ELLEN G. WHITE

ÌJÀKADÌ NLÁ NÁÀ

AWỌN IṢẸLẸ TI YOO YI ỌJỌ IWAJU RẸ PADA

Copyright © 2022 lati ọwọ Ile-iṣẹ Ellen G. White Estate.

A kọkọ tẹ ẹ jade ni ede Gẹẹsi bi The Great Controversy.

Iṣẹ-ọna ẹyin iwe jẹ ti Eduardo Olszewski ati Casa Publicadora Brasileira, Tatui, SP - Brazil
Olùtumọ̀: Adeleke, Aderẹmi Adefẹmi

Àtẹ̀kalẹ̀ lati ọwọ Ile-iṣẹ Ellen G. White Estate.
Àgbékalẹ̀ ìtẹ̀wé: Noto Sans 10
Ede: Yoruba

A mu awọn ẹsẹ Bibeli lati inu Bibeli Mimọ Alakọle. Copyright © 2012 lati ọwọ The Bible Society of Nigeria. A lo o pẹlu aṣẹ. A ni aṣẹ lori gbogbo iwe yii.

ISBN: 979-8-4003-0026-4

Gbogbo ẹtọ lori iwe naa wa lọwọ wa.

Lati mọ si nipa Ijakadi Nla Naa tabi Bibeli, ẹ jọwọ ẹ ṣe ibẹwo si www.thegreatcontroversy.org

Àwọn Akori

1. Ìparun Jérúsálẹmù....5
2. Inúnibíni Ní Ọgọrun Ọdún Àkọkọ....20
3. Àkókò Òkùnkùn Ti Ẹmí....27
4. Awọn Waldenses....35
5. John Wycliffe....47
6. Huss Ati Jerome....59
7. Ìyapa Luther Kúrò Ni Romu....75
8. Luther Niwaju Ìgbìmọ....92
9. Alatunṣe Ti Ilẹ Swistzerland....109
10. Ìdàgbàsokè iṣẹ Àtunṣe Ní Germany....118
11. Awọn Ijoye Fi Ẹhonu Han....127
12. Iṣẹ Àtunṣe Ni Orilẹ-Ede France....137
13. Netherlands Ati Scandinavia....155
14. Alatunṣe Ikẹyin Ni England....161
15. Bibeli Ati Idoju Ijọba Bolẹ Ni France....175
16. Awọn Baba Arinrin-Ajo....191
17. Awọn Akéde Òwúrọ....198
18. Alatunṣe Ti Ilẹ Amẹrika....210
19. Imọlẹ Laarin Okunkun....227
20. Isọji Nla Ti Ẹsin....235
21. Ikilọ Ti A Kọ Silẹ....248
22. Awọn Asọtẹlẹ Wa Si Imuṣẹ....259
23. Kini Ibi Mimọ?....271
24. Ninu Ibi Mimọ Julọ....280
25. Ofin Ọlọrun Wa Titi Lae....287
26. Iṣẹ Atunṣe....298
27. Isọji Ti Ode Oni....305

28. Didojukọ Akọsilẹ Nipa Igbesi Aye 317
29. Ipilẹṣẹ Iwa Buburu 326
30. Ikorira Laarin Eniyan Ati Satani 334
31. Aṣoju Awọn Ẹmi Eṣu 339
32. Awọn Idẹkun Satani 344
33. Itanjẹ Nla Akọkọ 353
34. Ṣe Awọn Eniyan Wa Ti Wọn Ti Ku Le Ba Wa Sọrọ? 366
35. Igbogunti Ominira Ẹri Ọkan 374
36. Ikọlu Ti N Bọ 387
37. Iwe Mimọ Gẹgẹ Bi Aabo 395
38. Ikilọ Ikẹyin 402
39. Akoko Idamu 409
40. A Gba Awọn Eniyan Ọlọrun Silẹ 424
41. Ile Aye Di Ahoro 436
42. Ariyanjiyan Naa Pari 442

1

Ìparun Jérúsálẹmù

"Ìbá ṣe pé ìwọ mọ, loni yii, ani ìwọ, ohun ti i ṣe ti alaafia rẹ! Ṣugbọn nisinsinyi, wọn pamọ kúro ni ojú rẹ. Nítori ọjọ n bọ fun ọ, tí awọn ọtá rẹ yoo wa yàrà ka ọ, wọn o si yí ọ ka, wọn o si ká ọ mọ ni ìhà gbogbo. Wọn o si wó ọ palẹ, àti àwọn ọmọ inú rẹ; wọn ki yoo si fi okuta kan sílẹ lori ara wọn; nítori ti ìwọ ko mọ ọjọ ibẹwo rẹ." Luku 19:42—44.

Jesu wo Jerusalẹmu lati ori-oke Olifi. Aworan ti o wà niwaju Rẹ dara, ó si tutu. Ó jẹ àkókò àjọ Ìrékọjá, lati gbogbo ilẹ ayé awọn ọmọ Jakọbu pejọ pọ sibẹ lati ṣe àjọyọ àjọdún nla orile ede wọn yii. Laarin àwọn ọgbà àti ọgbà àjàrà, ati lóri àwọn pápá oko túutu tí àwọn arìnrìnàjò pa àgọ wọn sí, a rí àwọn òkè kékèkẽ, àwọn aafin nla, àti àwọn ògiri aabo nla nla tí wọn nípọn ti Olú Ilu Israeli. Ọmọbìrin Síoni n rò nínú ìgbéraga rẹ lati sọ wípé, Mo jóko bí ọbabinrin, èmi kì yóò sì rí ìbànújé; Ó rẹwà nígbà náa ó sì rò wípé òun ní ààbò nínú ojú rere Ọrun bíi ti ìgbà ìsáaju nígbà tí ọba akọrin náa kọrin wípe: "Dídára ní ipò ìtẹdó, ayọ gbogbo ayé ni òkè Sioni . . . ìlú Ọba nlá." O. Dafidi 48:2. Ní ojútáyé ni ilé tẹmpili tó rẹwà náa wà. Ìtànsán oòrùn tí n wọ tàn sí ògiri olokuta iyebiye tí ó funfun bi yìnyín, ó tan ìmọlẹ padà lati enu ilẹkùn oníwúrà, àti ilé ìṣọ, àti ṣónṣo tẹmpili. "Ohun tí ó pé ní ẹwà," ó dúró, ohun àmúyangàn orílẹ èdè Ju. Èwo nínú àwọn ọmọ Israeli ni yóo bojú wo àwòrán yìí tí kì yóò kún fún ayọ àti ìyàlẹnu! Ṣùgbọn èrò míràn tí ó jìnnà réré ni ó kún ọkàn Jesu. "Nígbà tí Ó si súnmọ itòsí, Ó ṣíjú wo ìlú náà, Ó sì sọkún le lórí." Luku 19:41. Láarín àjọyọ ìwọlé pẹlú ìṣẹ́gun, nígbà tí a sì ń ju imọ ọpẹ, tí hòsanna ń ró padà láti orí àwọn òkè, tí ọpọ ohun ń pè É ní ọba, ń ṣe ni ìbànújẹ tí a kò lè ṣàlàyé

bo Olùràpadà aráyé lójiji. Òun Ọmọ Ọlọrun, Ẹni ìlérí Israeli, tí agbára Rẹ ti ṣẹgun ikú tí ó sì ti pe àwọn òndè Rẹ kúrò ní ipò òkú, ń sọkún, kì í ṣe ti ẹdùn ọkàn lásán, ṣùgbọn ti ìrora tí ó lágbára tí kò lè pamọra.

Kò sọkún fún ara Rẹ, bí ó tilẹ jẹ wípé Ó mọ ibi tí ẹsẹ Òun ń lọ. Níwájú Rẹ ni Getsemani wà níbi tí yoo ti jẹ ìrora ọkàn. Ẹnu ọnà—àgùntàn wà lẹbá ibẹ, nibi tí a máa n mú ẹran ìrúbọ gbà kọjá fún ọpọlọpọ ọdun, tí a o sì ṣí sílẹ fun nígbà tí a o "mu wá gẹgẹ bí àgùntàn tí a mú wá síwájú ẹni tí yóò pá." Aisaya 53:7. Ní itòsí ni Kalfari wa, ibi tí a ti ń kanni mọ àgbélèbú. Ní ojú ọnà tí Kristi yóò rìn láìpẹ ni ìbẹ̀rù òkùnkùn ńlá yóò wà, bí Ó ti ń fi ọkàn Rẹ ṣe ètùtù fún ẹṣẹ. Síbẹ kì í ṣe ìrònú ìrora tí ó ju ti èniyan lọ tí yóò jẹ ni ó da ìkuuku bo ẹmí tí kò ní ìmọ ti ara ẹni nìkan náà. Ó sọkún fún ọgọọrọ àwọn eniyan tí ìparun yóò dé bá ní Jerusalẹmu—nítorí ìfojú àti àìnírònúpìwàdà àwọn tí Ó wá láti bùkún fún àti láti gbàlà.

Ìtàn ìkẹ àti ìdáabòbò pàtàkì tí Ọlọrun fihàn fún àwọn eniyan Rẹ tí Ó yàn fún ọpọlọpọ ọdún ni ó ṣípayá síwájú Jesu. Níbẹ ni òkè Moria gbé wà, níbi tí ọmọ ìlérí tí a fẹ fi rúbọ tí kò sì janpata, tí a dè e mọ orí pẹpẹ—àpẹẹrẹ ìrúbọ Ọmọ Ọlọrun. Níbẹ ni a ti fi ìdí ìbùnkún májẹmú, ìlérí tí ó logo ti Mesaya múlẹ fún baba ìgbàgbọ. Jenesis 22:9, 16—18. Níbẹ ni iná ẹbọ tí ń gòkè lọ sí ọrun lati orí ilẹ ìpákà Ornani ti yí idà angẹli apanirun padà (1 Kronika 21)—àpeere tí ó tó fún ẹbọ àti ìbálàjà Olugbala fún eniyan ẹlẹṣẹ. Ọlọrun bu iyì fún Jerusalẹmu ju ohunkóhun lọ lórí ilẹ ayé. Ọlọrun ti "yan Jerusalẹmu," "Ó ti fẹ fún ibùgbé Rẹ." O. Dafidi 132:13. Nibẹ fún ọpọlọpọ ọdún, ni àwọn woli mímọ ti ṣe iṣẹ ìránṣẹ ìkìlọ wọn. Níbẹ ni àwọn alufa ti fi àwo tùràrí, tí ìkuuku òórùn tùràrí, pẹlú àdúrà àwọn olùjọsìn gòkè lọ síwájú Ọlọrun. Nibẹ ní ojoojúmọ ni a ti ń fi ẹjẹ ọdọ àgùntàn tí a pa rúbọ, èyí tí ó ń tọka sí Ọdọ Aguntan Ọlọrun. Nibẹ ni Jehofa ti fi ara Rẹ hàn lórí ìtẹ àánú. Níbẹ ni àkàsọ tí ó yanilẹnu nì dúró sí, èyí tí ó so ayé pọ mọ ọrun (Jẹnẹsis 28:12; Johannu 1:51)—àkàsọ lórí èyí tí àwọn angẹli Ọlọrun ń gòkè tí wọn sì ń sọkalẹ, tí ó ṣí ọnà sí ibi mímọ jùlọ sílẹ fún aráyé. Bí ó bá jẹ wípé Israeli gẹgẹ bí orílẹ èdè ṣe ìgbọran sí Ọlọrun ni, Jerusalẹmu ì bá dúró títí láe gẹgẹ bí àyànfẹ Ọlọrun. Jeremaya 17:21—25. Ṣugbọn ìtàn àwọn eniyan tí a bùkún fún yìí ṣe àfihàn ìfàsẹyin àti ìṣọtẹ. Wọn ṣe àtakò oore ọfẹ Ọrun, wọn ṣi anfani wọn lò, wọn gan anfani wọn.

Bí ó tilẹ jẹ wípé Israeli ti fi "àwọn òjíṣẹ Ọlọrun ṣe ẹlẹya, wọn kẹgàn ọrọ Rẹ, tí wọn sì fi àwọn woli Rẹ ṣẹsin" (2 Kronika 36:16), Ó sì fi ara Rẹ hàn fún wọn gẹgẹ bí "Oluwa Ọlọrun, alaanu, oloore ọfẹ, onípamọra tí Ó pọ ní oore àti òtítọ" (Eksodu 34:6); láìka ìkọsílẹ wọn látìgbàdégbà sí, àánú Rẹ sì ń tẹsíwájú pẹlú ìpẹ rẹ. Pẹlú ìkaanú ìfẹ tí ó ju ti baba

sí ọmọ tí ó ń tọjú lọ, Ọlọrun “rán àwọn òjíṣẹ Rẹ sí wọn, Ó ń dìde ní kùtùkùtù, Ó ṣì ń ránṣẹ, nítori tí Ó ní ìyọnú sí àwọn eniyan Rẹ àti sí ibùgbé Rẹ” 2 Kronika 36:15. Nígbàtí ìbáwí, ípẹ, ati ìkìlọ kùnà, Ó rán ẹbùn ọrun tí ó dára jùlọ sí wọn; àní Ó tú gbogbo ọrun sílẹ nínú ẹbùn kan ṣoṣo náà.

Ọmọ Ọlọrun fúnra Rẹ ni a rán láti pàrọwà sí ìlú tí kò ronúpìwàdà yìí. Kristi ni Ó mú Israeli jáde láti Ijipti wa gẹgẹ bí èso àjàrà tí ó dára. O. Dafidi 80:8. Owó ara Rẹ ni Ó fa àwọn alaigbagbọ tu kúrò níwájú rẹ. Ó gbìn wọn sí “orí òkè tí ó lọrá.” Ìkẹ ìdaabòbò Rẹ ni Ó fi yi ká. Àwọn ìránṣẹ Rẹ ni Ó rán láti máa tọjú rẹ. Ó sọ wípé “Kíló tún yẹ kí n ṣe fún ọgbà àjàrà Mi tí Èmi kòì tí ì ṣe si?” Aisaya 5:1—4. Bí ó tilẹ jẹ wípé nígbà tí Ó wò wipe o ye ki o mu eso wa, èso kikan ni o mu wá, sibẹ pẹlu ireti wipe yoo so eso, Ó funra Rẹ wa sinu ọgba àjara Rẹ boya o le gba a sile kuro ninu iparun. O gbẹ ilẹ yi àjara Rẹ ka; O wọn ọwọ rẹ, O si fẹran rẹ. Agara ko da A ninu akitiyan Rẹ lati ra ajara ti O funra Rẹ gbin yii padà.

Fun ọdun mẹta Oluwa imọlẹ ati ogo n lọ O si n bo laarin awọn eniyan Rẹ. O “rin káàkiri O si n ṣ‘oore, O n wo gbogbo awọn ti eṣu n jẹniya san,” O n ṣe iwosan fun awọn onirobinujẹ ọkan, O n tu awọn ti wọn wà ninu igbekun silẹ, O n la oju awọn afọju, O n mu arọ rin, ati ki odi o gbọran, O n sọ adẹtẹ di mimọ, O n ji oku dide, O si n waasu iyinrere fun awọn otoṣi. Ise 10:38; Luku 4:18; Matiu 11:5. Gbogbo eniyan ni a kede ipe oore ofe yii fun: “Ewa si ọdọ Mi, gbogbo ẹyin ti n ṣiṣẹ, ti a si di ẹru wuwo le lori, Emi o si fi isinmi fun yin.” Matiu 11:28.

Bi o tile je wipe a fi ibi san oore fun, ti a si fi ikorira san ifẹ Rẹ pada (O. Dafidi 109:5), O ṣe iṣẹ aanu Rẹ laikaarẹ. Ko si ẹni ti o wa aanu Rẹ ti O ta danu. Alarinkiri ti ko nile, ẹgan ati aini ni ipin Rẹ lojoojumọ, O gbe lati ṣe iranṣẹ fun aini awọn eniyan, ki O si mu ki ibanujẹ wọn o dinku, lati rọ wọn lati gba ẹbun iye. Ìgbi aanu ti awọn ọlọkan lile yii da pada pada wa pẹlu igbi ti o lagbara si ti o kun fun ikaanu, ati ifẹ ti a ko le fẹnu sọ. Ṣugbọn Israeli ti yi pada kuro lọdọ ọrẹ timọtimọ rẹ ati Ẹnikan soso ti O le ran an lọwọ. A gan ipe ifẹ Rẹ, a kọ imọran Rẹ silẹ, a si fi ibawi Rẹ ṣẹsin.

Wakati ireti ati idariji n sare kọja lọ; ago irunu Ọlọrun ti a fa sẹyin fun igba pipẹ ti fẹrẹ kun. Ìkuuku ti o n ko ara jọ pọ lati igba ifasẹyin ati iṣọtẹ ti o wa dudu ni akoko yii fun ijiya, ni o fẹ jabọ sori awọn eniyan ẹlẹṣẹ; Ẹni ti o si jẹ wipe Oun nikan ni O le gba wọn lọwọ idajọ ti o ku si dẹdẹ ni wọn ti gan, ti wọn kọ silẹ, ti o si ku diẹ fun wọn lati kan An mọ agbelebu. Nigba ti a ba gbe Kristi ko si ori agbelebu ni Kalfari, akoko Israeli gẹgẹ bi orilẹ ede ti Olorun ṣaanu fun, ti O si bukun fun yoo dopin. Adanu ọkan kan ṣoṣo jẹ ajalu ti o tobi ju

gbogbo ere ati iṣura aye yii lọ bi a ba fi wọn we ara wọn; ṣugbọn bi Kristi ti wo Jerusalẹmu, iparun odindi ilu nla, ti gbogbo orilẹ ede, naa wa niwaju Rẹ—ilu naa, orilẹ ede naa, ti o ti fi igba kan jẹ ayanfẹ Ọlọrun, iṣura aṣayan Rẹ.

Awọn woli ti sọkun lori ifaṣeyin Israeli ati iparun nla ti a o fi bẹ ẹṣẹ wọn wo. Jeremaya fẹ ki oju oun jẹ orisun oje, ki oun baa le sọkun lọsan ati loru nitori iparun ọdọmọbinrin awọn eniyan rẹ, nitori ti a ko agbo Oluwa lọ ni igbekun. Jeremaya 9:1; 13:17. Bawo ni ẹdun ọkan Rẹ a ti pọ to, Ẹni ti oju iwoye Rẹ wo ohun ti yoo ṣẹlẹ, ki i ṣe fun odun diẹ, ṣugbọn fun ọdun pipẹ! O wo angeli apanirun ti o gbe ida soke sori ilu ti o fi igba pipẹ jẹ ibugbe Jehofa. Lati ori oke Olifi, ni ibudo gan ti Titu ati awọn ọmọ ogun rẹ tẹdo si, O wo kọja afonifoji, awọn gbọngan ati ogiri mímọ, pẹlu oju ti o kun fun omije, o ri ni ọna ti o banilẹru, awọn ogiri ti awọn ẹgbẹgun ọta yipo. O gbọ iro ẹṣẹ awọn ọmọ ogun ti n tò lọwọ̀wọ lọ si oju ogun. O gbọ ohùn awọn iya ati ọmọ bi wọn ti n kigbe fun ounjẹ ninu ilu ti a kamọ. O ri ti a n fi ina jo awọn ile mimọ rẹ ti wọn lẹwa, ati awọn aafin ati ile iṣọ rẹ, ti ibi ti wọn wa ni igbakan ri di ahoro.

O fi oju inu wo o, O ri bi a ti fọn awọn eniyan majẹmu kaakiri si gbogbo orilẹ ede "bi ọkọ ti o bajẹ ninu aṣalẹ." Ninu idajọ ti aye yii, eyi ti o fẹ bọ lu awọn ọmọ rẹ, O ri ìdọgin akọkọ lati inu ago ibinu eyi ti yoo mu tan patapata ni akoko idajọ ikẹyin. Ikaanu Ọlọrun ati ifẹ tí ó ní ìyọnú ni o jade ninu awọn ọrọ ti o banininuje yii: "Jerusalẹmu, Jerusalẹmu, iwọ ti o ti pa awọn woli, ti o sì sọ awọn ti a rán si ọ ni okuta, igba melo ni Emi yoo ko awọn ọmọ rẹ jọ pọ, bi adiyẹ ti n radọ bo awọn ọmọ rẹ labẹ iyẹ rẹ, ṣugbọn iwọ kò jẹ." I ba ṣe wipe iwọ ti a ṣaanu fun ju gbogbo orilẹ ede lọ, mọ igba ibẹwo rẹ, ati awọn ohun ti wọn jẹ mọ alaafia rẹ! Mo ti dawọ angẹli idajọ duro, Mo ti pe ọ wa si ironupiwada, ṣugbọn pabo ni wọn jasi. Ki i tilẹ n ṣe iranṣẹ, aṣoju tabi awọn woli ni iwọ kọ silẹ tí o sì ṣátì, ṣugbọn Ẹni Mimọ Israeli, Olurapada rẹ. Bi a bá pa ọ run iwọ ni o fa a o. "Ẹyin ko ni wa si ọdọ Mi ki ẹ baa le ni iye." Matiu 23:37; Johannu 5:40.

Kristi ri apẹẹrẹ araye ti o ti yigbì ninu aigbagbọ ati iṣọtẹ, ti o n sare lọ pade idajọ ẹsan Ọlọrun ninu Jerusalẹmu. Iparun ìran ti o subu ti o wọ Ọ lọkan ni o mu ẹkun kíkoro jade lati ètè Rẹ wa. O ri akọsilẹ ẹṣẹ ti a to lẹsẹẹsẹ ninu oṣi, ẹkun ati ẹjẹ eniyan. Ọkan Rẹ kun fun ikaanu ainipẹkun fun awọn ti a n pọn loju ti a si n jẹ niya ninu aye; O fẹ lati tu gbogbo wọn lara. Ṣugbọn ọwọ Rẹ ko le yi igbi ibanujẹ wọn pada; ìwọnba awọn pérete ni yoo wa Orisun kan ṣoṣo wọn fun iranlọwọ. O ṣetan lati fi ọkan Rẹ lelẹ de oju iku, lati mu igbala wa si arọwọto wọn; ṣugbọn awọn diẹ ni yoo wa si ọdọ Rẹ ki wọn baa le ri iye.

Ọba ọrun n sọkun! Ọmọ Ọlọrun ayeraye n damu ninu ẹmi, irora ọkan tẹ ori Rẹ ba! Iṣẹlẹ yii jẹ iyalẹnu fun Ọrun. Aworan ti a ri nibi yii fi bi ẹṣẹ ti buru jojọ to hàn; o fi bi iṣẹ naa ti nira to ani fun Agbara Ayeraye, lati gba ẹlẹṣẹ la kuro ninu ayọrisi riru ofin Ọlọrun. Jesu wo iran eniyan ti o kẹyin, O ri aye ti o wa ninu iru itanjẹ kan naa ti o fa iparun Jerusalẹmu. Ẹṣẹ nla ti awọn Ju ṣẹ ni wipe wọn kọ Kristi silẹ; ẹṣẹ nla ti awọn Kristẹni yoo jẹ kikọ ofin Ọlọrun silẹ, ipilẹ ijọba Rẹ ni ọrun ati aye. A yoo gan ìlana Jehofa, a yoo si sọ di asan. Ọgọọrọ awọn eniyan ti wọn wa ninu igbekun ẹṣẹ, ti wọn jẹ ẹru Satani, ti o daju wipe wọn yoo jiya iku ẹẹkeji ni yoo kọ lati gbọ ọrọ otitọ ni ọjọ ibẹwo wọn. Ifọloju ti o banilẹru! Iraniye ti o ṣajeji.

Ọjọ meji ṣaaju ajọ Irekọja, nigbati Kristi ti kuro ni tẹmpili fun igba ikẹyin, lẹyin ti O ti ba agabagebe awọn adari awọn Ju wi, O jade pẹlu awọn ọmọ ẹyin Rẹ lọ si oke Olifi, O si joko ni ori pápá ni odikeji ilu naa. Lẹẹkansi O wo tẹmpili naa pẹlu ogo didan rẹ, ade ẹwa ti o de ori oke mimọ naa.

Ni ẹgbẹrun ọdun kan sẹyin, onísáamù ti kókìkí aanu Ọlọrun fun Israeli ni fifi ile mimọ Israeli ṣe ibugbe Rẹ: “Ni Salẹmu pẹlu ni agọ Rẹ wa, ati ibujoko Rẹ ni Sioni.” O “yan ẹya Juda, oke Sioni ti O fẹ. O si kọ ibi mimọ Re bi aafin ti o ga.” O. Dafidi 76:2; 78:68, 69. A kọ tẹmpili akọkọ ni àkókò ti nǹkan n lọ deede julọ ninu itan Israeli. Iṣura ti o pọ yanturu ni ọba Dafidi ko pamọ fun iṣẹ yii, a kọ iwe ilana ile naa ni abẹ imisi Ọlọrun. 1 Kronika 28:12, 19. Solomoni, ọba ti o gbọn julọ ninu awọn ọba Israeli ni o pari rẹ. Tẹmpili naa ni ile ti o logo julọ lori ilẹ aye yii. Sibẹ Ọlọrun kede nipasẹ woli Hagai nipa tẹmpili naa pe: “Ogo ile ikẹyin yii yoo tobi ju ti iṣaaju lọ.” “Emi yoo si mi gbogbo orilẹ ede, Ifẹ inu gbogbo awọn orilẹ ede yoo si de: Emi yoo si fi ogo kun ile yii, bẹẹni Oluwa awọn ọmọ ogun wi.” Hagai 2:9, 7.

Lẹyin igba ti Nebukadnesa pa tẹmpili naa run, awọn eniyan ti wọn pada lati oko ẹru ọlọjọ pipẹ, wa si orilẹ ede ti o ti di ahoro naa, ti awọn eniyan ti fẹrẹ sa kuro nibẹ tan, wọn tun un kọ ni bii ọdẹgbẹta (500) ọdun ṣaaju ibi Kristi. Awọn arugbo ti wọn ri ogo tẹmpili Solomoni wa ninu wọn, wọn sọkun nigbati wọn n fi idi ile tuntun lelẹ nitori pe ko rẹwa to ile ti iṣaaju. Woli naa ṣe alaye ero ti o wọpọ nigba naa bayii pe: “Tani o kù ninu yin ti o ri ile yii ninu ogo rẹ akọkọ? Bawo ni ẹ ti ṣe ri nisinsinyii? Ko ha dabi asan ni oju yin bi a ba fi wọn we ara wọn?” Hagai 2:3; Esra 3:12. Nigba naa ni a ṣe ileri wipe ogo ti ikẹyin yoo ju ti iṣaaju lọ.

Ṣugbọn tẹmpili keji ko logo to ti iṣaaju; bẹẹni ko ni awọn ohun ti a le fi oju ri ti wọn ṣe afihan iwapẹlu Ọlọrun ti wọn wa ninu tẹmpili akọkọ. Ko si ifihan agbara Ọlọrun ni àkoko ti a ya a si mimọ. A ko ri

ki ikuuku ogo o kún inu tẹmpili tuntun naa. Ina kankan ko sọkale lati ọrun wa lati jo ẹbọ lori pẹpẹ. Ko si Shekina laarin awọn kerubu ninu ibi mimọ julọ; ko si apoti ẹri, itẹ aanu ati walaa majẹmu nibẹ mọ. Ko si ohùn ti o kọ lati ọrun lati fi ifẹ Jehofa han fun alufa.

Fun ọpọlọpọ ọdun awọn Ju ti n ṣe akitiyan ṣugbọn laisi ayọrisi lati fihan ibi ti ileri Ọlọrun ti Hagai sọ yoo ti di mimuṣẹ; sibẹ igberaga ati aigbagbọ ra wọn niye lati mọ itumọ gan ti ọrọ woli naa ni. A ko bu ọla fun tẹmpili keji pẹlu ikuuku ogo Jehofa bikoṣe pẹlu iwapẹlu Ẹni ti kikun Ọlọrun n gbe inu Rẹ ninu ara—ti O jẹ Ọlọrun funra Rẹ ti a fihan ninu ẹran ara. “Ifẹ awọn orilẹ ede” wa sinu tẹmpili Rẹ nitooto nigba ti Ọkunrin Nasarẹti n kọni ti O si n wonisàn ninu ile mimọ naa. Nitori pe Kristi wa sinu rẹ, ati ninu eyi nikan ṣoṣo ni tẹmpili keji fi ni ogo ju ti iṣaaju lọ. Ṣugbọn Israeli ti le Ẹbun ọrun jinna si ara rẹ. Pẹlu bi Olukọ onirẹlẹ naa ti jade kuro lẹnu ilẹkun oniwura rẹ, ni ọjọ naa ni ogo fi ile naa silẹ titi lae. Nigba naa ni ọrọ Olugbala wa si imuṣẹ wipe: “A fi ile yin silẹ fun yin ni ahoro.” Matiu 23:28.

Awọn ọmọlẹyin Kristi kun fun ibẹru ati iyalẹnu pẹlu asọtẹlẹ Kristi nipa iparun tẹmpili naa, wọn si fẹ lati mọ awọn itumọ ọrọ Rẹ ni kikun. Ọrọ, iṣẹ ati ọgbọn ikọle ni a lo sori ile naa lati le jẹ ki ogo rẹ o pọ si. Ọba Hẹrọdu Nla ná ọrọ awọn Romu ati awọn Ju sori tẹmpili naa ni ọna akoyawọ. Ani olori ijọba aye bukun fun pẹlu awọn ẹbun rẹ. Awọn okuta mabu ti wọn funfun ti wọn si tobi jọjọ ti a ko wa lati Romu nitori rẹ, wa lara ohun ti a fi kọ ọ. Awọn okuta wonyi ni awọn ọmọ ẹyin pe akiyesi Ọga wọn si wipe: “Wo iru okuta ati iru ile ti o wa nihin yii!” Maku 13:1.

Jesu fesi si awọn ọrọ wọnyi lọna to lọwọ ti o si yanilẹnu: “Lootọ ni mo wi fun yin, ki yoo si okuta kan nihin yii ti a o fi silẹ lori ekeji, ti a ki yoo wo lulẹ.” Matiu 24:2.

Awọn ọmọ ẹyin so iparun Jerusalẹmu papọ mọ awọn iṣẹlẹ ipadabọ Jesu ninu ogo lati wa gba itẹ ijọba aye, ki O si ṣe idajọ awọn Ju ti ko ronupiwada, ki O si gba orilẹ ede naa kuro lọwọ ajaga Romu. Oluwa ti sọ fun wọn pe Oun n padabọ lẹẹkeji. Nitori naa, nigba ti a mẹnuba idajọ lori Jerusalẹmu, ọkan wọn lọ si ibi ipadabọ naa; bi wọn si ṣe yi Olugbala po ni ori oke Olifi, wọn beere: “Nigba wo ni awọn nnkan wọnyi yoo ṣẹ? Ati kini yoo jẹ ami wiwa Rẹ ati ti opin aye?” Ẹsẹ 3.

Ninu aanu a ṣiji bo ọjọ iwaju kuro loju awọn ọmọ ẹyin. Bi awọn nnkan buburu meji ba ye wọn yékeyeke nigba yẹn—ijiya ati iku Olurapada ati iparun ilu wọn ati tẹmpili—ipaya a bo wọn mọlẹ. Kristi ṣe alaye awọn iṣẹlẹ pataki ti yoo ṣẹlẹ ṣaaju opin àkókò fun wọn. Ọrọ Rẹ ko ye wọn daradara nigba naa; ṣugbọn a o la itumọ rẹ ye awọn eniyan Rẹ bi wọn ba ṣe nilo awọn ẹkọ to wa ninu rẹ. Asọtẹlẹ ti O

sọ ní orisi itumọ meji; nigba ti o sọ nipa iparun Jerusalẹmu, o tun ṣe apẹẹrẹ awọn ajalu ọjọ nla ti o kẹyin. Jesu kede idajọ ti yoo wa si ori Israeli alaigbọran si etigbọ awọn ọmọ ẹyin, paapaa julọ idajọ igbẹsan ti yoo wa si ori wọn fun kikọ Mesaya silẹ ati fun kikan An mọ agbelebu. Awọn ami ti ko ṣe e ṣimọ ni yoo wa ṣaaju opin ti o lẹru naa. Akoko buburu yoo yara wá kankan ati lọgan. Jesu tun kilọ fun awọn atẹle Rẹ pe: " Nigba ti ẹyin ba ri ikorira ti isọdahoro, ti a ti ẹnu woli Danieli sọ, ti o ba duro ni ibi mimọ (ẹni ti o ba ka a, ki oye ki o ye:) nigba naa ni ki awọn ti n bẹ ni Judea o salọ si awọn ori oke." Matiu 24:15, 16; Luku 21:20, 21. Nigba ti a ba gbe ọpagun abọrisa awọn ara Romu ró sori ilẹ mimọ, eyi ti o jinna diẹ si odi ilu, nigba naa ni ki awọn atẹle Kristi o wa aabo nipa fífi ẹsẹ fẹ. Nigba ti wọn ba ti ri ami ikilọ, gbogbo awọn ti wọn ba fẹ sa asala ko gbọdọ dẹsẹ duro. A nilati ṣe igbọran si ami ikilọ lati salọ ni gbogbo ilẹ Judea ati ni Jerusalẹmu funra rẹ lọgan. Ẹni ti o ba wa ni ori ile ko gbọdọ sọkalẹ wọ inu ile, ani lati mu ohun ti o ṣe iyebiye julọ. Awọn ti wọn ba n ṣisẹ ninu oko tabi ọgba ajara ko gbọdọ pada lati mu aṣọ ti wọn bọ kalẹ nigba ti wọn n ṣisẹ ninu ooru ọjọ naa. Wọn ko gbọdọ lọra fun isẹju kan ki wọn ma baa ni ipin ninu iparun gbogboogbo naa.

Ki i ṣe wipe a ṣe Jerusalẹmu lọṣọ nikan ni ni akoko ijọba Hẹrọdu, ṣugbọn pẹlu kikọ awọn ile isọ, ogiri ati odi alagbara, ni afikun pẹlu agbara ibi ti a tẹ ilu naa do si, o di ilu ti a ko le fi ipa wọ. Ni asiko yii, ẹnikẹni ti yoo ba sọ asọtẹlẹ iparun rẹ ni gbangba, yoo dabi ataniloyẹ ti n ya were ni bii Noah ni akoko rẹ. Ṣugbọn Kristi ti sọ wipe: "Ọrun ati aye yoo kọja lọ, ṣugbọn ọrọ Mi ki yoo kọja lọ." Matiu 24:35. Nitori awọn ẹṣẹ rẹ, a ti kede ibinu nla le Jerusalẹmu lori, orikunkun aigbagbẹ rẹ si jẹ ki o daju. Oluwa ti sọ nipasẹ woli Mika pe: "Gbọ eyi Emi bẹ yin, ẹyin olori ni Jakọbu, ati ẹyin alakoso ile Israeli ti o korira idajọ, ti o si n yi otitọ pada. Wọn fi ẹjẹ kọ Sioni ati Jerusalẹmu pẹlu aisedeede. Awọn olori rẹ n ṣe idajọ nitori abẹtẹlẹ, awọn alufa rẹ n kọni nitori owo isẹ, awọn woli rẹ n sọtẹlẹ fun owo: sibẹ wọn o ha gbẹkẹle Oluwa, ki wọn si wipe, Oluwa ko ha wa laarin wa bi? ibi kan ki yoo ba wa." Mika 3:9—11.

Awọn ọrọ wọnyi ṣe alaye ni pipe iwa ibajẹ ati ododo ara ẹni awọn olugbe Jerusalẹmu. Nigba ti wọn n sọ wipe wọn n tẹle ilana ofin Ọlọrun láìyẹsẹ, wọn n ru gbogbo agbekalẹ ofin. Wọn korira Kristi nitori iwa mimọ ati ailabawọn Rẹ fi aisedeede wọn han; wọn si fi ẹsun kan-An wipe Oun ni O ṣe okunfa gbogbo isoro ti o de ba wọn ni ijiya fun ẹṣẹ wọn. Bi o tilẹ jẹ wipe wọn mọ Ọ ni alailẹṣẹ, wọn sọ wipe iku Rẹ ṣe pataki fun aabo orilẹ ede wọn. Awọn adari Ju wipe, "Bi a ba fi I silẹ, gbogbo eniyan yoo gba A gbọ: awọn ara Romu yoo si wa gba

ilẹ ati orilẹ ede wa pẹlu.” Johanu 11:48. Bi a ba jọwọ Kristi lọwọ fun pipa wọn le jẹ eniyan ti o lagbara ti o tun wa nisọkan lẹẹkan si. Wọn ba ronu bẹẹ, wọn wa fi ohun ṣọkan ninu ipinu olori alufaa, wipe o san ki ẹnikan o ku ju ki gbogbo orilẹ ede o ṣegbe lọ.

Bayii ni awọn adari Ju ṣe kọ “Sioni pẹlu ẹjẹ, ati Jerusalẹmu pẹlu aiṣedeede.” Mika 3:10. Ati pẹlu, nigba ti wọn pa Olugbala wọn nitori pe O ba ẹṣẹ wọn wi, ododo ara ẹni wọn pọ debi wipe wọn si ri ara wọn gẹgẹ bi eniyan ti Ọlọrun ṣaanu fun, wọn si n reti ki Oluwa gba wọn lọwọ awọn ọta wọn. Woli naa tẹsiwaju wipe: “Nitori naa, nitori yin ni a o ṣe ro Sioni bi oko, Jerusalẹmu yoo di okiti ati oke nla ile bi ibi giga igbo.” Ẹsẹ 12.

Fun bi ogoji ọdun lẹyin ti Kristi ti funra Rẹ kede iparun Jerusalẹmu, Oluwa fa idajọ Rẹ lori ilu ati orilẹ ede naa seyin. Ipamọra Ọlọrun lori awọn ti wọn kọ iyinrere Rẹ silẹ, ti wọn tun pa Ọmọ Rẹ jẹ eyi ti o yanilẹnu. Owe igi ti ko so eso ṣe afihan ibaṣepọ Ọlọrun pẹlu orilẹ ede Ju. Aṣẹ naa ti jade wa, “gee lulẹ, eeṣe ti o fi n gba ilẹ lasan?” (Luku 13:7) ṣugbọn aanu Ọlọrun si fi wọn silẹ fun igba diẹ. Ọpọlọpọ si wa laarin awọn Ju ti ko ni oye nipa iwa ati iṣẹ Kristi. Ati pe, awọn ọmọ koi tii jẹ anfani tabi gba imọlẹ ti awọn òbi wọn kẹgan. Nipasẹ iwaasu awọn apostoli ati awọn ẹmẹwa wọn, Ọlọrun yoo jẹ ki imọlẹ o tan si wọn; a yoo jẹ ki wọn o ri bi asọtẹlẹ ti ṣe di mimuṣẹ, ki i ṣe ninu ìbí ati igbesi aye Kristi nikan, ṣugbọn ninu iku ati ajinde Rẹ. A ko dá awọn ọmọ lẹbi nitori ẹṣẹ awọn obi wọn; ṣugbọn pẹlu oye nipa gbogbo imọlẹ ti a fun awọn obi wọn, ti awọn ọmọ tun kọ awọn imọlẹ ti a fifun wọn ni afikun silẹ, wọn di alababapin ẹṣẹ awọn obi wọn, wọn si kun odiwọn ẹṣẹ awọn obi wọn de ẹnu.

Ipamọra Ọlọrun si Jerusalẹmu tubo n jẹ ki wọn yigbì ninu aironupiwada si ni. Ninu ikorira ati iwa ika wọn si awọn ọmọ ẹyin Jesu, wọn kọ ipe aanu ikẹyin silẹ. Nigba naa ni Ọlọrun mu aabo Rẹ kuro lori wọn, O si mu agbara ti n kawọ Satani ati awọn angẹli rẹ ko kuro. A wa fi orilẹ ede naa silẹ fun akoso olórí ti o yan. Awọn ọmọ rẹ ti gan oore ọfẹ Kristi eyi ti i ba kawọ ero buburu wọn kò, awọn wọnyi ni wọn wa ṣẹgun wọn. Satani wa ru eyi ti o gbona ti ko si ni ironu julọ ninu ifẹkufẹ ọkan wọn soke. Awọn eniyan ko ronu; wọn ti kọja ironu—oofa ọkan ati ibinu ti ko nitumọ ni o n dari wọn. Wọn dabi Satani ninu iwa ika wọn. Ainifọkantan, owú, ikorira, ija, iṣọtẹ, ati ipaniyan ni o wa laarin wọn, ninu idile, ati ni orilẹ ede, laarin awọn ti wọn ga julọ ati laarin awọn ti wọn kere julọ. Ko si aabo nibi kankan. Awọn ọrẹ ati ibatan n dalẹ ara wọn. Awọn obi n pa awọn ọmọ wọn, bẹẹni awọn ọmọ n pa awọn obi wọn. Awọn adari awọn eniyan naa ko ni agbara lati ṣe akoso ara wọn. Oofa ọkan ti ko ni akoso sọ wọn

di onroro. Awọn Ju gba ẹri eke lati da Ọmọ Ọlọrun alaiṣẹ lẹbi. Bayii ifẹsunkanni lọna eke ko jẹ ki aye wọn o nitumọ. Nipa iṣẹ wọn, wọn ti n sọ ọ lati igba pipẹ wa wipe: “Jẹ ki Ẹni Mimọ Israeli o kuro niwaju wa.” Aisaya 30:11. Bayi a fi ifẹ ọkan wọn fun wọn. Ibẹru Ọlọrun ko di wọn lọwọ mọ. Satani ti di olori orilẹ ede naa, awọn alakoso ilu ati ẹsin wa labẹ isakoso rẹ.

Ni igba miran awọn olori ẹgbẹ alatako a parapọ lati ko ẹru awọn ti wọn wa ninu ahamọ wọn, ti wọn a si fiya jẹ wọn, wọn a bá ara wọn ja wọn a si pa ara wọn ni ipakupa ailaanu. Ani wipe tẹmpili jẹ mimọ ko dawọ iwa onroro buburu wọn duro. A pa awọn olujọsin niwaju pẹpẹ, a si sọ ibi mimọ di aimọ pẹlu oku awọn ti a pa. Sibẹ ninu ifọju ati iyaju sọ ọrọ òdì wọn, awọn ti n wu iwa ika yii n sọ ọ ni gbangba wipe wọn ko ni ibẹru wipe a o pa Jerusalẹmu run nitori pe ilu Ọlọrun funra Rẹ ni. Lati le fi idi agbara wọn mulẹ daradara, wọn fun awọn woli eke ni owo abẹtẹlẹ, ani nigba ti awọn ọmọ ogun Romu n dó ti tẹmpili, lati le kede ki awọn eniyan o duro de igbala lati ọdọ Ọlọrun. Titi ti gbogbo rẹ fi pari, awọn eniyan gbagbọ wipe Ẹni Giga julọ yoo ja fun wọn lati ṣẹgun awọn ọta wọn. Ṣugbọn Israeli ti fi ẹgan kọ aabo Ọlọrun silẹ, bayi ko ni aabo. Jerusalẹmu ti o yẹ ki a kaanu fun! ti a faya latari ija abẹle, ẹjẹ awọn ọmọ rẹ ti wọn funra wọn ṣe iku pa ti sọ awọn adugbo rẹ di alawọ pupa fòò, nigba ti awọn ọmọ ogun ajeji n wọ awọn odi rẹ ti wọn si n pa awọn ọmọ ogun rẹ.

Gbogbo awọn asọtẹlẹ ti Jesu sọ nipa iparun Jerusalẹmu ni wọn wa si imuṣẹ patapata. Awọn Ju ni iriri otitọ awọn ọrọ ikilọ rẹ: “Iru oṣuwọn ti ẹyin ba fi wọn, oun ni a o fi wọn fun yin.” Matiu 7:2.

Awọn ami ati iṣẹ iyanu ṣẹlẹ ti wọn sọ nipa ajalu ati iparun ti n bọ. Laarin oru, imọlẹ ti ki i ṣe lasan tan si ori tẹmpili ati pẹpẹ. Lori ikuuku awọsanma nigba ti oorun n wọ, a ri aworan awọn kẹkẹ ẹṣin ati awọn jagunjagun ti wọn n ko ara wọn jọ pọ fun ogun. Awọn ìró ti wọn ṣeni ní kàyéfì dẹru ba awọn alufa ti wọn n jọsin ninu ibi mimọ ni alẹ; ilẹ mì, a si gbọ ohùn pupọ ti n kigbe wipe: “Ẹ jẹ ki a kuro nibi.” Ilẹkun nla ti o wa ni iha ila oorun, ti o wuwo debi wipe o maa n nira fun bi ogun eniyan lati pádé, ti a si fi awọn irin nla de mọ okuta ti o le koko ni o ṣi silẹ ni oru ọganjọ lairi ohun ti o ṣi.

Fun ọdun meje ọkunrin kan n lọ sókè sódò kaakiri awọn adugbo Jerusalẹmu, o n kigbe iparun ti yoo wa si ori ilu naa. O n kọ orin arò lọsan ati loru bayi pe: “Ohùn kan lati ila oorun wa! ohun kan lati iwọ oorun wa! ohùn kan lati afẹfẹ mẹrẹẹrin! Ohùn kan ti o tako Jerusalẹmu ati tẹmpili! ohùn kan ti o tako ọkọ iyawo ati iyawo! ohùn kan ti o tako gbogbo eniyan!” A ti ẹni ajeji yii mọ inu tubu, a si nàá, ṣugbọn ko ṣe àròyé kan. Idahun rẹ si ifiyajẹni ati iwọsi ti a fi kan-an

ni wipe: “Ègbé, ègbé ni fun Jerusalẹmu!” “egbe, egbe ni fun awọn olugbe inu rẹ!” Ko dawọ igbe ikilọ rẹ duro titi ti a fi pa a ninu ìdóguntì ti o sọtẹlẹ.

Ko si Kristẹni kankan ti o ṣegbe sinu iparun Jerusalẹmu. Kristi ti ki awọn ọmọ ẹyin Rẹ nilọ, gbogbo awọn ti wọn gba ọrọ Rẹ gbọ ni wọn wọna fun ami ti O ṣeleri. Jesu wipe, “Nigba ti ẹyin ba ri ti awọn ẹgbẹgun yi Jerusalẹmu ka, ki ẹ mọ wipe iparun rẹ ti sunmọ etile. Ki ẹni ti o wa ni Judea o salọ si awọn òkè; ki awọn ti wọn wa laarin rẹ o jade kuro.” Luku 21:20, 21. Lẹyin ti awọn Romu labẹ Cestius yi ilu naa ka, lairotẹlẹ wọn fi ibudo wọn silẹ nigba ti ohun gbogbo mu ki o rọrun fun wọn lati ṣe akọlu. Awọn ti a d‘ógun tì, tí atako ṣiṣe ti su ti fẹrẹ juwọ silẹ, nigba ti olori ogun awọn Romu ṣàdédé fa awọn ọmọ ogun rẹ seyin laisi idi kan pato. Ṣugbọn aanu Ọlọrun ni o n ṣe akoso awọn iṣẹlẹ fun rere awọn eniyan Rẹ. A ti fi ami ti a ṣeleri han fun awọn Kristẹni ti n ṣọna, bayi anfani ti ṣi silẹ fun gbogbo ẹni ti o ba fẹ lati ṣe igbọran si ikilọ Jesu. Awọn iṣẹlẹ yii ṣe rẹgi to bẹẹ gẹẹ ti ko fi si eyikeyi ninu awọn Ju tabi awọn Romu ti o le dí awọn Kristẹni lọwọ ninu asala wọn. Nigba ti Cestius n pada seyin, awọn Ju sa tẹle awọn ọmọ ogun rẹ; nigba ti awọn mejeeji n wọya ija, awọn Kristẹni ni anfani lati fi ilu naa silẹ. Ko si ọta kankan ni ẹyin odi ilu ni akoko yii lati da wọn duro. Ni akoko idogun tì yii, awọn Ju n pejọ pọ si Jerusalẹmu lati ṣe ajọdun Ajọ Agọ, bayii ni awọn Kristẹni ṣe ri àyè salọ laisi idiwọ. Laifi ẹsẹ falẹ, wọn salọ si ibi aabo—ilu Pella, ni ilẹ Perea, ni ikọja Jordani.

Awọn ẹgbẹgun Ju ti wọn n sa tẹle Cestius ati awọn ọmọ ogun rẹ lẹyin, kọlu wọn latẹyin wa pelu ero lati pa wọn run patapata. Pẹlu inira nla ni awọn Romu fi le fasẹyin tan patapata. Awọn Ju si pada sile pẹlu ikogun wọn, wọn si wọ Jerusalẹmu pẹlu iṣẹgun laisi adanu kan to dabi alara. Ṣugbọn ibi lasan ni aṣeyọri wọn yii ko ba wọn. O fun wọn ni ẹmi orikunkun ati atako si awọn ara Romu eyi ti o mu iparun ti ko se e sọ ba ilu ti a ti fi gegun naa.

Ijamba ti o banilẹru ni o subu lu Jerusalẹmu nigba ti Titu pada do ti ilu naa. Orisirisi eto ni wọn n lọ ninu ilu naa ni akoko ajọ Irekọja, nigba ti ọpọlọpọ awọn Ju pejọ pọ sinu ogiri rẹ. Àká ounjẹ wọn, eyi ti o ba jẹ wipe bi wọn bá lo o daradara i ba to wọn fun ọpọ ọdun, ni a ti kọkọ fi ṣofo latari owú ati igbẹsan awọn onijagidijagan, ni bayi wọn wa ni gbogbo iriri ipaya ebi. A ta oṣuwọn ọka kan fun iwọn talẹnti kan. Ijiya ebi naa pọ to bẹẹ gẹẹ ti awọn eniyan n ge awọ igbanu, bata, ati ti ibori wọn je. Ọpọ eniyan yoo yọ kẹlẹ jade lalẹ lati lọ wa awọn eweko to wa lẹyin odi ilu, bi o tilẹ jẹ wipe ọpọ ninu wọn ni a mu ti a pa pẹlu ifiyajẹni kikoro, ni ọpọ igba, a maa n fi ipa gba eyi ti awọn

ti wọn ba pada de ni alaafia ba ri lọwọ wọn, bi o tilẹ jẹ wipe wọn fi ẹmi ara wọn wewu. Ijiya ti o buru jai ni awọn ti wọn ba ni agbara fi maa n jẹ awọn alaini eniyan lati le fi ipa gba ounjẹ perete ti wọn ba ni ni ipamọ. Awọn ti wọn ba ti jẹun yo ni wọn saba maa n wu iru iwa ika yii pẹlu erongba lati le ri ounjẹ ko pamọ fun ọjọ iwaju.

Ẹgbẹgbẹrun ni wọn padanu ẹmi wọn nitori iyan ati ajakalẹ arun. O dabi ẹnipe ifẹ si ara ẹni ti parun tan. Awọn ọkọ n ja iyawo wọn lole, bẹẹ ni awọn iyawo n ṣe pẹlu. Awọn ọmọ a maa ja ounjẹ gba kuro lẹnu awọn obi arugbo wọn. Ibeere woli naa wipe, "Njẹ obirin ha le gbagbe ọmọ omu rẹ"? ri idahun laarin odi ilu ti iparun de ba naa: "Owo awọn obinrin alaanu ti sé awọn ọmọ tikara wọn: awọn wọnyi ni ohun jijẹ fun wọn ni igba wahala ọdọmọbinrin awọn eniyan mi." Aisaya 49:15; Ẹkun Jeremaya 4:10. Bẹẹ ni a mu ikilọ asọtẹlẹ ti a ṣe ni ẹgbeje (1400) ọdun seyin wa si imuṣẹ: "Obinrin ti awọ rẹ tutu ninu yin ti o si ṣe ẹlẹgẹ, ti ko jẹ da aṣa àti fi atẹlẹsẹ rẹ kan ilẹ nitori ikẹra ati iwa ẹlẹgẹ, oju rẹ yoo koro si ọkọ ookan aya rẹ, ati si ọmọ rẹ okunrin, ati ọmọ rẹ obinrin, . . . ati si awọn ọmọ rẹ ti yoo bi; nitori pe oun o jẹ wọn ni ikọkọ nitori aini ohunkohun; ninu ìdótì ati ihamọ naa, ti ọta rẹ yoo ha ọ mọ ni ibode rẹ." Deuteronomi 28:56, 57.

Awọn adari Romu ṣe akitiyan lati fiya jẹ awọn Ju ki wọn baa le juwọ silẹ. A na awọn ẹlẹwọn ti wọn ṣe agidi nigba ti a mu wọn, a fiya jẹ wọn a si kan wọn mọ agbelebu niwaju ogiri ilu naa. Ọgọrọrun ni a n ṣe bayi pa lojoojumọ, ti iṣẹ to n dẹru bani yii si n tẹsiwaju titi ti Afonifoji Jehosafati ati Kalfari fi kun fun agbelebu debi wipe ko si àyè lati kọja laarin wọn. Ọna ti o buru patapata gbaa ni a fi bẹ egun ti a sọ jade niwaju àga idajọ Pilatu wò: "Ki ẹjẹ Rẹ o wà lori wa, ati awọn ọmọ wa." Matiu 27:25.

Titu i ba mọọmọ fi opin si iṣẹlẹ buburu yii ti Jerusalẹmu i ba masi jiya idajọ rẹ ni kikun. Ipaya mu bi o ṣe ri awọn oku ni okiti ninu awọn afonifoji. A fi bi ẹni ti o wa ninu iran, o wo tẹmpili ologo naa lati oke Olifi wa o si paṣẹ pe ki a maṣe fi ọwọ kan ọkan ninu awọn okuta rẹ. Ki o to ṣe akitiyan lati gba ilu olodi yii, o ṣipẹ fun awọn adari Ju lati maṣe kan an nipa fun òhun lati sọ ibi mimọ wọn di aimọ pẹlu ẹjẹ. Bi wọn yoo ba jade wa lati wa ja nibomiran, ara Romu kan ki yoo ba tẹmpili mimọ naa jẹ. Josefọsi funra rẹ rọ wọn ni ọna ti o muni lọkan julọ lati juwọ silẹ, lati gba ara wọn, ilu wọn ati ibi ijọsin wọn silẹ. Ṣugbẹn egun kikoro ni wọn fi da a lohun, a sọ òkò lu olubalaja eniyan wọn ti o kẹyin, bi o ti n bẹbẹ pẹlu wọn. Awọn Ju ti kọ ipẹ Ọmọ Ọlọrun silẹ, ni akoko yii iṣaroye ati ẹbẹ a tilẹ se ọkan wọn le si lati ṣe atako titi de opin ni. Pabo ni akitiyan Titu lati daabo bo tẹmpili naa ja si; Ẹni ti o tobi ju u lọ ti sọ wipe a ki yoo fi okuta kan lelẹ lori ekeji.

Agidi awọn adari awọn Ju ati iwa ọdaran to buru jai ti wọn n wu ninu ilu ti a dó tì yii ru ibinu ati ikorira awọn ara Romu soke, lẹyin-ọrẹyin Titu pinu lati fi ibinu kọlu tẹmpili naa. O si pinu sibẹ wipe bi o ba ṣe e ṣe a ki yoo pa a run. Ṣugbọn a ko ṣe igbọran si aṣẹ rẹ. Lẹyin igba ti o wọ inu agọ rẹ lọ lalẹ, awọn Ju jade wa lati inu tẹmpili wọn lati kọlu awọn ọmọ ogun ti wọn wa ni ita. Ninu ijakadi yii, ọmọ ogun kan ju igi ina lati ẹnu ilẹkun wa, lọgan bi awọn yara ti a fi igi kedari ṣe lọṣọ ninu ile mimọ naa ṣe gbina niyẹn. Titu sare lọ sibẹ pẹlu awọn adari ogun rẹ, o si paṣẹ ki awọn ọmọ ogun o pa ina naa. Wọn ko da a lóhùn. Ninu ibinu wọn, awọn ọmọ ogun ju igi ina sinu awọn iyàrá ti wọn wà lẹbaa tẹmpili naa, lẹyin eyi wọn fi idà wọn pa ọpọlọpọ awọn ti wọn wa aabo si ibẹ. Ẹjẹ n san lori awọn atẹgun bi omi. Ẹgbẹẹgbẹrun awọn Ju ni wọn ṣegbe. Ninu ariwo ogun naa, a gbọ ọpọlọpọ ohun ti n kigbe wipe: "Ìkábódì!"—ogo ti kuro.

"Titu ri wipe ko ṣe e ṣe ki oun o dawọ ibinu awọn ọmọ ogun naa duro; oun pẹlu awọn oṣiṣẹ rẹ wọ inu tẹmpili naa, wọn si yẹ inu rẹ wo. Ẹwa rẹ ya wọn lẹnu, niwọn igba ti ina koi tii wọ inu ibi mimọ, o ṣa ipa ikẹyin lati da a si, o sare jade lẹẹkan si lati ba awọn ọmọ ogun rẹ sọrọ lati pa ina naa. Olori ogun ọrun Liberalis fẹ fi ipa mu wọn ṣegbọran; ṣugbọn apọnle wọn fun olootu ijọba ko ni itumọ loju ikorira wọn si awọn Ju, ifẹ lati jagun ati ireti lati ri ikogun. Awọn ọmọ ogun ri ohun gbogbo to yi wọn ka bi wọn ti n dan gbinrin pẹlu wura, ti wọn tun dan si nitori ina ti n jo; wọn ro ni ọkan wọn pe isura ti ko ṣe e ṣiro ni a to jọ sinu ibi mimọ. Ọmọ ogun kan ti a ko fiyesi fi ṣugudu ti n jona si ara ilẹkun: gbogbo ile naa ni o gbina lọwọ kan. Eefin ti o dudu pẹlu ina ni o lé awọn ọgagun jade, bẹẹ ni a fi ile ọlọwọ naa silẹ fun atubọtan rẹ.

Iṣẹlẹ yii jẹ eyi ti o buru ni oju awọn ara Romu, kini yoo jẹ si awọn ara Ju? Ori oke ti o n ṣe akoso ilu naa n jona bi oke onina ti n ṣe eefin. Ni meni meji ni gbogbo ile naa subu pẹlu ariwo nla ti ina si bo gbogbo wọn. Awọn orule ti a fi kedari ṣe dabi ọwọ ina; awọn ṣonṣo ori tẹmpili dabi ina nla; awọn ilẹkun ile iṣọ n ju ọwọ ina ati eefin soke. Awọn oke ti wọn yi i ka mọlẹ; awọn eniyan si ko ara wọn jọ pọ lẹlẹgbẹjẹgbẹ, wọn n woran pẹlu ibanujẹ ọkan bi iparun naa ti n tẹsiwaju: ogiri ati ẹba oke ilu naa kun fun awọn eniyan, oju awọn kan kọrẹ lọwọ nitori ẹdun ọkan, nigbati awọn miran n kigbe ẹsan ti ko nitumọ. Ariwo awọn ọmọ ogun Romu bi wọn ti n sare lọ soke sodo, pẹlu igbe awọn alajakuakata ti wọn n ṣegbe ninu ina dapọ mọ iro ina ati iro iṣubu awọn igi nla nla. Awọn oke da iro igbe awọn ti wọn wa lori oke pada; ni gbogbo akoko yii, awọn ogiri n da iro igbe ati ẹkun pada. Awọn ti wọn ti fẹrẹ kú nitori ìyàn lo gbogbo agbara ti o ku ninu wọn lati kigbe arò ati iparun.

“Ipakupa ti o n lọ ninu ile tilẹ tun buru jai ju bi a ti ri lati ita lọ. Ọkunrin ati obinrin, agba ati ọmọde, awọn alakatakiti ati awọn alufa, awọn ti wọn n jà ati awọn ti wọn bẹbẹ fun aanu ni a ge lulẹ laidákansí. Iye awọn ti a pa pọ ju ti awọn ti n pani lọ. Awọn ọmọ ogun nilati gun ori okiti awọn ti wọn ti ku kọja ki wọn ba le tẹsiwaju ninu iṣẹ iparun wọn.”

Lẹyin iparun tẹmpili naa, gbogbo ilu naa subu si ọwọ awọn ara Romu ni kia. Awọn adari Ju sa kuro ninu awọn ile iṣọ agbara wọn ti Titu si ba wọn ti wọn ṣofo. O yọju wo wọn pẹlu iyanu o si sọ wipe Ọlọrun ti fi wọn le oun lọwọ; nitori ko si iru ẹrọ naa bi o ti wu ki o lagbara to ti o le bori awọn odi alagbara rẹ. A wó ilu ati tẹmpili naa palẹ de ipilẹ wọn, a si ro ilẹ naa ti ibi mimọ duro le lori “bi oko.” Jeremaya 26:18. O le ni milliọnu kan awọn Ju ti wọn ṣegbe ninu idogunti naa ati ipaniyan ti o tẹle; a ko awọn ti ko ku ninu ogun ni igbekun, a ta wọn bi ẹru, a wọ wọn lọ si Romu lati ṣe ayẹsi iṣẹgun aṣẹgun wọn, a ju wọn si ẹranko ninu gbọngan igbafẹ, a fọn wọn kaakiri gbogbo aye bi alainile.

Awọn Ju ni won rọ ṣẹkẹṣẹkẹ ara wọn; awọn funra wọn ni wọn kun ago ijiya wọn. Wọn n kore ohun ti ọwọ wọn gbin ninu iparun ti o de ba wọn gẹgẹ bi orilẹ ede, ati ninu ijiya ti o tẹle ifọnka wọn lasan ni. Woli naa sọ wipe: “Israeli iwọ ti pa ara rẹ run;” “nitori iwọ ti ṣubu nitori aiṣedeede rẹ.” Hosea 13:9; 14:11. A saba maa n ṣe agbekalẹ ijiya ti a fi bẹ wọn wo gẹgẹ bi aṣẹ taara lati ọdọ Ọlọrun wa. Bayi ni atanniiẹ nla naa ṣe n fi iṣẹ ọwọ rẹ pamọ. Nipa fifi orikunkun kọ ifẹ ati aanu Ọlọrun silẹ, awọn Ju jẹ ki a mu aabo Ọlọrun ti o wa lori wọn kuro, a si gba Satani laaye lati dari wọn bi o ti fẹ. Awọn iwa ika ti a wu ni akoko iparun Jerusalẹmu jẹ ifihan agbara igbẹsan Satani lori awọn ti wọn fi ara wọn si abẹ iṣakoso rẹ.

A ko le mọ iye ti a jẹ Kristi fun alaafia ati aabo ti a n jẹgbadun. Agbara ikalọwọko Ọlọrun ni koi ti i jẹ ki iran eniyan o bọ si ọwọ iṣakoso Satani patapata. Awọn alaigbọran ati alailọpẹ ni idi nla lati fi imoore wọn han fun aanu ati ipamọra Ọlọrun ni dida agbara buburu ati agbara ika ẹni ibi ni duro. Ṣugbọn nigba ti eniyan ba kọja odiwọn ipamọra Ọlọrun, a o mu ikalọwọko naa kuro. Ọlọrun ko duro gẹgẹ bi olumuṣẹ idajọ ẹṣẹ fun ẹlẹṣẹ; ṣugbọn a fi awọn ti wọn kọ aanu Rẹ silẹ si ara wọn lati kore ohun ti wọn gbin. Gbogbo itansan imọlẹ ti a kọ silẹ, gbogbo ikilọ ti a gan ti a ko ṣe igbọran si, gbogbo ifẹkufẹ ọkan ti a tẹ lọrun, gbogbo ẹṣẹ si ofin Ọlọrun, jẹ irugbin ti a gbin ti yoo mu ikore ti o daju wa. Ẹmi Ọlọrun ti ẹlẹṣẹ n fi gbogbo igba n kọ silẹ, ni a o mu kuro lọdọ rẹ lẹyin-ọrẹyin, ti ko sì ní sí agbara lati ṣe akoso ero buburu inu ọkan, ko si ni si aabo kuro ninu iwa ika ati ikorira Satani.

Iparun Jerusalẹmu jẹ ikilọ nla ti o si lẹrù fun gbogbo awọn ti wọn n fi ẹbun oore ọfẹ Ọlọrun ṣere, ti wọn n kọ ipe aanu Ọlọrun silẹ. Ko si ibi ti a tun ti ri ijẹri ti o yeni yeke nipa ikorira Ọlọrun fun ẹṣẹ, ati nipa ijiya ti o daju ti yoo wa si ori ẹlẹṣẹ.

Asọtẹlẹ Olugbala nipa ibẹwo idajọ lori Jerusalẹmu yoo ni imuṣẹ miran, eyi ti iparun yẹn jẹ òjiji lasan fun. A le ri iparun aye ti o kọ aanu Ọlọrun silẹ ti o tun tẹ ofin Rẹ loju ninu atubọtan ilu ti a yan yii. Akọsilẹ nipa ijiya eniyan ti aye ti ri ni gbogbo akoko iwa ọdaran ọlọjọ gbọọrọ jẹ eyi ti o banininujẹ. O maa n banilọkanjẹ, o si maa n su ni nigba ti a ba n ro o. Ohun ti o buru jọjọ ni o maa n jẹ atubọtan kikọ aṣẹ Ọrun silẹ. Ṣugbọn iṣẹlẹ ti o buru ju eyi lo ni a ṣe alaye rẹ ninu ifihan nipa ọjọ iwaju. Awọn akọsilẹ ateyinwa—irukerudo ọlọjọ gbọọrọ ti wọn to lẹsẹẹsẹ, ija, ati idoju ijọba bolẹ, "ogun awọn jagunjagun . . . pẹlu ariwo iporuuru ati aṣọ ti a yi ninu ẹjẹ" (Aisaya 9:5)—kini awọn nnkan wọnyi jasi ni afiwe pẹlu ibẹru ọjọ naa nigba ti a ba mu Ẹmi Ọlọrun ti n káni lọwọ ko kuro patapata lori awọn ẹni buburu, ti ko ni si nibẹ mọ lati dawọ itusita ifẹkufẹ ọkan eniyan ati ibinu gbigbona eniyan duro! Aye yoo ri ni ọna ti koi ti i riri atubọtan iṣakoso Satani.

Ṣugbọn ni ọjọ naa bii ti akoko iparun Jerusalẹmu, a o gba awọn eniyan Ọlorun silẹ, gbogbo awọn ti a kọ orukọ wọn sinu iwe iye. Aisaya 4:3. Kristi sọ pe Oun n bọ lẹẹkeji lati ko awọn eniyan Rẹ ti wọn jẹ olooto si sí ọdọ ara Rẹ: "Nigba naa ni gbogbo ẹya aye yoo kaanu, wọn yoo si ri Ọmọ eniyan ti yoo maa ti oju ọrun bọ ti Oun ti agbara ati ogo nla. Yoo si ran awọn angẹli Rẹ pẹlu ohùn ipe nla, wọn o si ko gbogbo awọn ayanfẹ Rẹ lati origun mẹrẹẹrin aye jọ, lati ikangun ọrun kan de ekeji." Matiu 24:30, 31. Nigba naa ni yoo fi ẹmi ẹnu Rẹ pa awọn ti ko ṣe igbọran si iyinrere, yoo si pa wọn pẹlu itansan wiwa Rẹ. 2 Tẹsalonika 2:8. Bi ti Israeli ni igba atijọ, awọn eniyan buburu ni wọn pa ara wọn run; wọn n ṣubu nipasẹ aiṣedeede wọn. Nipa igbesi aye ẹṣẹ, wọn ti pin ara wọn niya pẹlu Ọlọrun to bẹẹ gẹẹ ti iwa buburu fi ba iṣẹda wọn jẹ, ti ifarahan ogo Rẹ yoo jasi ina ajonirun fun wọn.

Ki awọn eniyan o sọra ki wọn ma baa gbagbe ẹkọ ti a fifun wọn ninu ọrọ Kristi. Bi O ti ki awọn ọmọ ẹyin Rẹ nilọ nipa iparun Jerusalẹmu, ti O fun wọn ni àmì nipa iparun ti o n bọ; ki wọn baa le sa asala; bẹẹ gẹgẹ ni O ṣe ki araye nilọ nipa iparun ikẹyin ti O si fun wọn ni ami wiwa Rẹ, ki gbogbo awọn ti wọn ba fẹ le sa fun ibinu ti n bọ. Jesu sọ wipe: "Àmì yoo wà ninu oorun, ati oṣupa ati irawọ ati lori ile aye idamu fun awọn orilẹ ede." Luku 21:25; Matiu 24:33; Maku 13:24—26; Ifihan 6:12—17. Gbogbo awọn ti wọn n wo awọn ami wiwa Rẹ wọnyi a "mọ wipe o ti sunmọ etile, ani ni ẹnu ilẹkun." Matiu 24:33. "Ẹ maa ṣọna nigba naa" ni ọrọ igbaniniyanju Rẹ. Marku

10:35. A ko ni fi awọn ti wọn ba ṣe igbọran si ikilọ yii sinu okunkun ti ọjọ naa a fi ba wọn lairotẹlẹ. Ṣugbọn fun awọn ti ko ni ṣọna, “ọjọ Oluwa n bọ wa bi ole ni oru.” 1 Tẹsalonika 5:2—5.

Araye ko ṣetan lati gba iṣẹ iranṣẹ fun akoko yii bi awọn Ju ko ṣe ti ṣetan lati gba ikilọ Olugbala nipa Jerusalẹmu. Bi o ti wu ki o ri, ọjọ Oluwa yoo de ni airotẹlẹ si awọn alaiwabiọlọrun. Nigba ti aye ba n tẹsiwaju ninu akitiyan rẹ, ti awọn eniyan n fi ara wọn jin fun faaji, fun idoko owo, fun irinkerindo, fun wiwa owó; nigba ti awọn olori ẹsin ba n kokiki itẹsiwaju ati ọlaju inu aye, ti a si fi ọkan awọn eniyan balẹ ninu aabo asan—nigba naa, ni iparun ojiji yoo de si ori awọn alaibikita ati awọn alaiwabiọlọrun bi ole ti n ja ile ti ko ni aabo ni oru ọganjọ, “wọn ki yoo si le sa asala.” Ẹsẹ 3.

2

Inúnibíni Ní Ọgọrun Ọdún Àkọkọ

Nigbati Jesu sọ fun awọn ọmọ ẹyin Rẹ nipa atubọtan Jerusalẹmu ati awọn iṣẹlẹ nipa ipadabọ Rẹ lẹẹkeji, O sọ iriri awọn eniyan Rẹ pẹlu lati àkókò ti a o gba A kuro lọwọ wọn, titi fi di akoko ipadabọ Rẹ ninu agbara ati ogo fun idande wọn. Lati oke Olifi Olugbala bojuwo ìjì ti yoo kọlu ijọ apostoli; ni wiwo ọjọ iwaju láwòfín, oju Rẹ ri ni kedere awọn iji nla apanirun ti yoo kọlu awọn atẹle Rẹ ni akoko okunkun ati inunibini ti n bọwa. Ninu awọn ọrọ ṣoki ti itumọ wọn banilẹru O sọ nipa ohun ti awọn alaṣẹ aye yii yoo ṣe si ijọ Ọlọrun. Matiu 24:9, 21, 22. Awọn atẹle Kristi gbọdọ rin oju ọna irẹni silẹ, itiju ati ijiya kan naa ti Ọga wọn rin. A o fi iru iṣọta kan naa ti a fihan fun Olugbala araye han fun gbogbo awọn ti wọn ba gbagbọ ninu orukọ Rẹ.

Itan ijọ akọkọ ṣe ijẹri si ọrọ Olugbala. Awọn agbara ile aye ati ti ipo oku kọ oju ija si Kristi ninu awọn atẹle Rẹ. Ẹsin ibọrisa ri wipe bi iyinrere ba fi le ṣegun, a o gba awọn tẹmpili ati pẹpẹ oun kuro; nitori naa o lo awọn agbara rẹ lati pa ẹsin Kristẹni run. A tan iná inunibini silẹ. A gba ohun ìní awọn Kristẹni kuro lọwọ wọn, a si lé wọn kuro ninu ile wọn. Wọn “fi ara da wahala ijiya nla.” Heberu 10:32. Wọn “ri idanwo ẹlẹya lile ati ina, ati ju bẹẹ lọ ti ìdè ati ẹwọn.” Heberu 11: 36. Ọpọ awọn eniyan ni wọn fi ẹjẹ wọn ṣe ami si ijẹri wọn. Ọlọla ati ẹru, ọlọrọ ati otoṣi, ọmọwe ati alaimọkan, gbogbo wọn ni a pa lapapọ lailaanu.

Awọn inunibini wọnyi, bẹrẹ labẹ Nero ni akoko ijẹriku Pọlu, o tẹsiwaju fun ọpọ ọdun, nigba miran ọwọ rẹ a silẹ, nigba miran a gbona janjan. Awọn ẹsun iwa ọdaran ti o buru jai ni a fi n kan awọn Kristẹni lọna eke, wọn a si sọ wipe awọn ni wọn fa orisirisi awọn ajalu

nla—iyan, ajakalẹ arun ati ilẹ ríri. Bí wọn ti di ẹni ti gbogbo ilu korira ti wọn si n funra si, awọn olofofo ṣetan lati fi alaiṣẹ han nitori owo. A da wọn lẹbi bi aṣọte si ijoba, ẹta ẹsin ati iyọnu laarin awujọ. Ọpọlọpọ wọn ni a ju si awọn ẹranko buburu tabi ti a sun nina láàyè ní awọn gbọngan igbafẹ. A kan awọn miran mọ agbelebu; a da awọ ẹranko buburu bo awọn miran, a wa ju wọn sinu ibi iṣere ki aja baa le fa wọn ya. Ijiya wọn ni a saba maa fi n ṣe ohun igbafẹ to ga julọ nibi ayẹyẹ ara ilu. Ọpọ eniyan ni wọn pejọ lati jẹ igbadun iṣẹlẹ naa ti wọn yoo si fi atẹwọ ati ẹrin dahun si ikerora iku wọn.

Bi ẹran ije ni a ṣe maa n le awọn atẹle Kristi kiri ni ibikibi ti wọn ba sa si fun aabo. A fi ipa mu wọn lati wa aabo ninu ibi isọdahoro ti o farasin. “Alaini, ẹni ti a n pọn loju, ati ẹni ti a n da loro; (awọn ti aye ko yẹ fun:) wọn rin kiri ninu aṣalẹ, ati lori oke ati ninu ibugbe awọn ẹranko, ati iho abẹ ilẹ.” Ẹsẹ 37, 38. Awọn ibi isinku—si abẹ ilẹ di ibugbe fun ọpọlọpọ. Awọn iho gigun ti a gbẹ gba inu ilẹ ati apata wa labẹ awọn oke lẹyin ilu Romu; iho ilẹ naa ṣokunkun, o si gun ni ọpọlọpọ ibusọ kọja odi ilu. Ninu awọn ibi ifarapamọsi abẹ ilẹ wọnyi ni awọn atẹle Kristi n sin oku wọn si; nibi si ni wọn maa n sa si nigba ti a ba funra si wọn tabi ti a ba fi ofin dè wọn. Nigba ti Afun-ni-ni ẹmi ba ji awọn ti wọn ti ja ija rere dide, ọpọ awọn ajẹriku Kristi ni yoo jade wa lati awọn iho to ṣokunkun wọnyi.

Awọn ajẹri fun Jesu wọnyi pa igbagbọ mọ lailabawọn labẹ inunibini to gbona janjan. Bi o tilẹ jẹ wipe wọn ko ni anfani lati ri itura kankan, wọn ko ri imọlẹ oorun, ti wọn fi ibi okunkun, sugbon ti o ni alaafia ṣe ibugbe wọn, wọn ko ṣe aroye kankan. Wọn gba ara wọn niyanju pẹlu ọrọ igbagbọ, suuru, ati ireti lati fi ara da ijiya ati ipọnju. Ipadanu gbogbo ibukun aye ko le mu ki wọn kọ igbagbọ wọn ninu Kristi silẹ. Idanwo ati inunibini tilẹ n mu wọn sunmọ isinmi ati ere wọn si ni.

Bii awọn iranṣẹ Ọlọrun ti igbaani, ọpọlọpọ ni a “ni a dá lóró, ti wọn kọ lati gba idasilẹ; ki wọn baa le ri ajinde ti o dara julọ gba.” Ẹsẹ 35. Awọn wọnyi ranti ọrọ Ọga wọn wipe, nigba ti a ba n ṣe inunibini si wọn nitori Kristi, ki wọn kun fun ayọ gidigidi, nitori pupọ ni ere wọn ni ọrun; nitori bẹẹ gẹgẹ ni a ṣe inunibini si awọn woli ti wọn wa ṣaaju wọn. Wọn yọ nitori pe a ka wọn yẹ lati jiya nitori otitọ, orin iṣẹgun si ti inu ina ti n jo goke wa. Ni wiwoke pẹlu igbagbọ wọn ri Kristi ati awọn angẹli Rẹ ti wọn rọgbọku lori odi ọrun, wọn n wo wọn pẹlu ifẹ ọkan giga, ti wọn si n fiye si idurosinsin wọn pẹlu inu didun. Ohùn kan kọ si wọn lati itẹ Ọlọrun wa wipe: “Jẹ olootọ titi de oju iku, Emi yoo si fun ọ ni ade iye.” Ifihan 2:10.

Pabo ni akitiyan Satani lati fi iwa ipa pa ijọ Ọlọrun run jasi. Ijakadi nla naa ninu eyi ti awọn ọmọ ẹyin Jesu padanu ẹmi wọn ko dopin

pẹlu awọn a-gbé-àsíá olootọ ti wọn ṣubu lẹnu iṣẹ wọn yii. Nipa iṣubu wọn ṣẹgun. A pa awọn oṣiṣẹ Ọlọrun, ṣugbọn iṣẹ Rẹ n rọra n tẹsiwaju. Iyinrere n tẹsiwaju lati tan kalẹ, iye awọn ti wọn gba a gbọ si n pọ si. O wọ awọn ẹkun ti asia ijọba Romu ko le wọ. Kristẹni kan sọ bayi nigba ti o n jiroro pẹlu awọn alaṣẹ ti wọn jẹ abọrisa ti wọn jẹ ki inunibini o tẹsiwaju, wipe: Ẹ le "pa wá, e le fi iya jẹ wa, e le dá wa lẹbi. . . . Aisododo yin jẹ ẹri si wipe a wa ni ailẹṣẹ. . . . Bẹẹ ni iwa ika yin ko ran yin lọwọ." O jẹ ipe ti o lagbara lati mu ki awọn miran o ri ohun ti wọn gbagbọ. "Bi ẹ ṣe n ge wa lulẹ, bẹẹ ni iye wa n pọ si. Irugbin ni ẹjẹ awọn Kristẹni jẹ."

Ọpọlọpọ ni a ju sinu tubu tabi ti a pa, ṣugbọn awọn miran dide lati rọpo wọn. Awọn ti a pa nitori Kristi jẹ ti Rẹ, O si ka wọn si aṣẹgun. Wọn ti ja ija rere, wọn yoo si gba ade ogo nigba ti Kristi ba de. Ijiya ti awọn Kristẹni n farada mu wọn sunmọ ara wọn ati Olurapada wọn si. Apẹẹrẹ igbesi aye wọn ati ijẹri iku wọn jẹ ẹri ti o duro ṣinṣin si otitọ; nibi ti a ko si lero rara, awọn atẹle Satani n fi iṣẹ re silẹ wọn si n duro si abẹ asia Kristi.

Nitori naa Satani pero lati doju ija ko ijọba Ọlọrun daradara nipa ríri asia rẹ sinu ijọ Kristẹni. Bi a ba le tan awọn atẹle Kristi jẹ ki a si mu ki wọn ṣe ohun ti ko dun mọ Ọlọrun ninu, agbara wọn, igboya wọn ati iduroṣinṣin wọn a baku, wọn a si ṣubu bi ẹran ijẹ.

Alatako nla wa ṣa ipa lati fi ọgbọn ẹwẹ gba ohun ti o baku lati fi agbara gba. Inunibini dawọ duro, ṣugbọn a fi ẹwa ọrọ ati ọla aye, eyi ti o lewu rọpo. Awọn abọrisa gba die ninu igbagbọ Kristẹni, nigba ti wọn ko awọn otitọ yooku ti wọn ṣe pataki silẹ. Wọn jẹwọ lati gba Jesu gẹgẹ bi Ọmọ Ọlọrun ati lati gbagbọ ninu iku ati ajinde Rẹ, ṣugbọn wọn ko ni idalẹbi ẹṣẹ, wọn ko si rí idi fun ironupiwada tabi iyipada ọkan. Pẹlu bi wọn ti gba diẹ ninu igbagbọ Kristẹni, awọn naa sọ wipe ki wọn gba diẹ lara igbagbọ wọn, ki gbogbo wọn le wa ni irẹpọ lori ipele igbagbọ ninu Kristi.

Ni akoko yi ijọ wa ninu ewu ti o banilẹru. Ibukun ni ọgba ẹwọn, ifiyajẹni, ina ati ida jẹ bi a ba fi we eleyi. Apa kan lara awọn Kristẹni duro gbọin, wọn wipe wọn ko le ba aye rẹ. Awọn miran fara mọ jijuwọsilẹ, tabi titun diẹ lara awọn ohun ti wọn gbagbọ ṣe ki wọn si darapọ mọ awọn ti wọn gba diẹ lara igbagbọ Kristẹni, wọn sọ wipe, eyi le jẹ ọna fun wọn lati yipada patapata. Akoko yii jẹ akoko iporuuru ọkan nla fun awọn atẹle Kristi tootọ. Labẹ afarawe Kristẹni, Satani n ti ara rẹ wọ inu ijọ, lati ba igbagbọ rẹ jẹ ati lati yi ọkan wọn kuro ninu ọrọ otitọ.

Ọpọlọpọ awọn Kristẹni ni wọn gba lẹyin-ọrẹyin lati fa ọwọ odiwọn sisalẹ, iṣọkan wá wà laarin ẹsin Kristẹni ati ẹsin ibọrisa. Bi o tilẹ jẹ

wipe awọn abọrisa sọ wipe wọn ti yi pada, ti wọn si da ara pọ mọ ijọ, wọn si dirọ mọ aṣa ibọrisa wọn, wọn tilẹ yi ohun ti wọn n jọsin si ere Jesu, ani ti Maria ati ti awọn eniyan mimọ ni. Bayi ni iwukara ẹlẹgbin ibọrisa ti a mu wọ inu ijọ ṣe tẹsiwaju ninu isẹ buburu rẹ. A ko awọn ikọni ti ko bojumu, ilana isin eke, ati aṣa ibọrisa wọ inu igbagbọ ati ijọsin rẹ. Bi awọn atẹle Kristi ṣe n darapọ mọ awọn abọrisa, bẹẹ ni ẹsin Kristẹni ṣe n dibajẹ, ti ijọ si padanu iwa mimọ ati agbara rẹ. Ṣugbọn awọn miran wà ti awọn itanjẹ wọnyi ko ṣi lọna. Wọn si jẹ olootọ si Ipilẹsẹ otitọ, wọn si jọsin Ọlọrun nikan ṣoṣo.

Orisi isọri meji ni o saba maa n wa laarin awọn ti wọn pe ara wọn ni atẹle Kristi. Nigba ti isọri kan n ṣe ayẹwo igbesi aye Olugbala ti wọn si n fi tọkantọkan wá lati tun ibaku wọn ṣe ati lati wà ni ibamu pẹlu Apẹrẹ naa, isọri keji kọ awọn otitọ ti wọn han kedere ti wọn fi awọn aṣisẹ wọn han silẹ. Ani nigba ti ijọ wa ni ipo ti o dara julọ ki i ṣe gbogbo awọn ti wọn wa ninu rẹ ni wọn jẹ olootọ, oniwamimọ, ati olododo. Olugbala kọ ni wipe a ko gbọdọ gba awọn ti wọn mọọmọ n da ẹṣẹ sinu ijọ; sibẹ O da ara Rẹ pọ mọ awọn ti iwa wọn kò pé, O si fun wọn ni anfani ikọni ati apẹrẹ Rẹ, ki wọn baa lè ni oore ọfẹ lati ri awọn aṣisẹ wọn ki wọn si ṣe atunṣe. Lara awọn apostoli mejila ni Judasi ọdalẹ wà. A ko gba Judasi nitori pe iwa rẹ ko pe, ṣugbọn pẹlu iwa aipe rẹ. A so o pọ mọ awọn ọmọ ẹyin ki o le mọ ohun ti iwa Kristẹni i ṣe nipasẹ ẹkọ ati apẹrẹ Kristi, ki o si ri awọn aṣisẹ rẹ, ki o le ronupiwada, ati pẹlu oore ọfẹ Ọlọrun, ki o fọ ọkan rẹ mọ nipa "ṣisẹ igbọran si otitọ." Ṣugbọn Judasi ko rin ninu imọlẹ ti a fi oore ọfẹ gbà laaye lati tan si i. Nipa dida ẹṣẹ o pe idanwo Satani wá. Eyi ti o buru ninu iwa rẹ ni okun ti o pọ si. O fi ọkan rẹ silẹ fun isakoso agbara okunkun, inu bi nigba ti a bá bá aṣisẹ rẹ wi, bayi ni o ṣe ṣe titi ti o fi wu iwa buburu ni fifi Ọga rẹ han. Bẹẹ gẹgẹ ni awọn ti wọn fẹran iwa buburu labẹ ijẹwọ iwabiọlọrun ṣe n korira awọn ti wọn n damu alaafia wọn nipa dídá iwa ẹṣẹ wọn lẹbi. Nigba ti aaye bá gbà wọn, bii Judasi, wọn yoo fi awọn ti wọn ba wọn wi fun rere wọn han.

Awọn apostoli ṣe alabapade awọn ti wọn jẹwọ iwabiọlọrun ṣugbọn ti wọn fẹran ẹṣẹ labẹlẹ ninu ijọ. Anania ati Safira wu iwa atanniję, wọn n dibọn bi ẹnipe wọn fi gbogbo rẹ sile fun Ọlọrun, nigba ti wọn fi ojukokoro kó diẹ pamọ fun ara wọn. Ẹmi otitọ fi bi awọn alafẹnujẹ yii ti ri gan-an han, idajọ Ọlọrun si mu abawọn ẹlẹgbin yii kuro ninu ìwà-ní-mímọ ijọ. Ẹri si Ẹmi Kristi ti n da nnkan mọ ninu ijọ jẹ ẹru fun awọn alagabagebe ati oniwa buburu. Wọn kò lè wà ni ibaṣepọ pẹlu awọn ti wọn fi igba gbogbo jẹ aṣoju Kristi ni iwa ati ìṣe; bi idanwo ati inunibini ṣe dé si awọn atẹle Rẹ, awọn ti wọn ṣetan lati kọ ohun gbogbo silẹ nitori otitọ nikan ni wọn fẹ lati di ọmọ ẹyin Rẹ. Niwọn

igba ti inunibini tẹsiwaju, ijọ wa ni mimọ. Ṣugbọn bi o ti dáwọ duro, awọn eniyan ti ifọkansin ati iṣododo wọn kò kún tó darapọ mọ wọn, ọna si ṣi silẹ fun Satani lati ri ibudo.

Ṣugbọn ko si ibaṣepọ laarin Ọmọ Alade imọle ati ọmọ alade okunkun, bẹẹ ni ko le si ibaṣepọ laarin awọn atẹle wọn. Nigbati awọn Kristẹni gba lati ni ibaṣepọ pẹlu awọn ti wọn ko yipada kuro ninu ẹsin ibọriṣa tan, wọn wọ oju ọna ti o n lọ jinna si otitọ. Inu Satani dun wipe oun tan ọpọ ninu awọn atẹle Kristi jẹ. O wa lo agbara rẹ lori awọn wọnyi daradara, ó sì mí si wọn lati ṣe inunibini si awọn ti wọn jẹ olootọ si Ọlọrun. Ko si ẹni ti o ni oye lati ṣe atako igbagbọ Kristẹni tootọ bi awọn ti wọn ti fi igba kan ri jẹ olugbeja rẹ; awọn Kristẹni ti wọn fa seyin wọnyi, ní dídarapọ mọ awọn abọriṣa ti ko yipada tan, wa kọ oju ija wọn si awọn kókó ti wọn ṣe pataki ninu awọn ikọni Kristi.

Awọn ti wọn fẹ jẹ olootọ wa nilo lati ṣe giri bi wọn ba fẹ duro gbọin lati tako itanjẹ ati iwa eeri ti a n wọ ni aṣọ mimọ ti a si n mu wọ inu ijọ. A kọ Bibeli silẹ gẹgẹ bi òdiwọn igbagbọ. A pe ikọni nipa ominira ẹsin ni ẹkọ odi, a korira awọn ti wọn gbagbọ ninu rẹ, a sì fi ofin de wọn.

Lẹyin ijakadi gbigbona ọlọjọpipẹ, awọn olododo perete pinnu lati maṣe ni ibaṣepọ kankan pẹlu ijọ apẹyinda bi o ba kọ lati ya ara rẹ kuro ninu èké ati ibọriṣa. Wọn ri wipe iyapa ṣe pataki bi wọn ba fẹ ṣe igbọran si ọrọ Ọlọrun. Wọn ko gbọdọ ni ifarada fun aṣiṣe ti o lewu fun ọkan wọn, ki wọn si fi apẹẹrẹ ti yoo ṣe ijamba fun arọmọdọmọ wọn lelẹ. Wọn ṣetan lati ṣe ohunkohun ti o ba wà ni ibamu pẹlu igbọran si Ọlọrun lati le ri alaafia ati iṣọkan; ṣugbọn wọn ro wipe alaafia ọun á ti wọn jù bi o ba nilo ki wọn pa igbagbọ wọn tì. Bi o ba jẹ wipe nipa fifa otitọ ati ododo seyin nikan ni a file ri iṣọkan, ẹ jẹki iyatọ o wà, ani ogun pẹlu.

Ì ba dara fun aye ati ijọ bi iru ẹmi ti o n dari awọn ọkan ti wọn duro ṣinṣin wọnyi ba le soji ninu ọkan awọn eniyan Ọlọrun. Ainibikita ti o banilẹru ni awọn eniyan ni si awọn ikọni ti wọn jẹ opomulero igbagbọ Kristẹni. Èrò naa n gbilẹ kan wipe wọn ko ṣe pataki to bẹẹ. Ifaseyin yii n fi okun kún ọwọ awọn aṣoju Satani, ti o fi jẹ wipe awọn ẹkọ èké ati itanjẹ buburu eyi ti awọn olootọ latẹyinwa fi ẹmi wọn wewu lati doju ija kọ ati lati tu asiri wọn ni ọpọlọpọ ti wọn pe ara wọn ni atẹle Kristi n fi oju rere wò.

Awọn Kristẹni akọkọ jẹ eniyan pataki nitootọ. Igbesi aye àilabawọn wọn ati igbagbọ ti ko yẹsẹ wọn jẹ ibawi àtìgbàdégbà to n damu alaafia awọn ẹlẹṣẹ. Bi wọn ko tilẹ pọ niye, ti wọn ko ni ọrọ, ipò, tabi oyè ni àwujọ wọn jẹ ìpayà fun awọn aṣebi nibikibi ti a ba ti mọ iwa ati ikọni wọn. Nitori idi eyi awọn eniyan buburu korira wọn, ani

bi Keeni alaiwabiọlọrun ti korira Abeli. Fun idi kan naa ti Keeni fi pa Abeli ni awọn ti wọn n wá lati dawọ idanilẹkun Ẹmi Mimọ duro ṣe pa awọn eniyan Ọlọrun. Fun idi kan naa ni awọn Ju ṣe kọ Olugbala silẹ ti wọn si kan-An mọ agbelebu—nitori ìwà ailabawọn ati iwa mimọ Rẹ jẹ ibawi atigbadegba fun imọtara-ẹni-nikan ati iwa ibajẹ wọn. Lati àkoko Kristi titi di isinsinyii, awọn atẹle Rẹ nitootọ si n ru ẹmi ikorira ati atako awọn ti wọn fẹran ti wọn si n rin ni ọna ẹṣẹ soke. Bawo wa ni a ṣe le pe iyinrere ni iṣẹ iranṣẹ alaafia? Nigba ti Aisaya so asọtẹlẹ nipa ìbí Mesaya, o pe E ni “Ọmọ Alade Alaafia.” Nigba ti awọn angẹli kede fun awọn oluṣọ aguntan wipe a bi Kristi, wọn kọrin ni oju ofurufu Betlẹhẹmu wipe: “Ogo ni fun Ọlọrun ni oke ọrun, ati ni ori ilẹ aye, alaafia, ifẹ inu rere si eniyan.” Luku 2:14. O dabi ẹnipe iyatọ wà laarin awọn ọrọ asọtẹlẹ wọnyi ati awọn ọrọ Kristi: “Emi kò wá lati ran alaafia, bikoṣe idà.” Matiu 10:34. Ṣugbọn bi o ba yeni daradara, awọn mejeeji wa ni ìbámu ti o peye pẹlu ara wọn. Iyinrere jẹ iṣẹ iranṣẹ alaafia. Ẹsin Kristẹni jẹ ilana ti i ba tan alaafia, iṣọkan, ati idunnu kaakiri gbogbo aye bi a ba gba a ti a si ṣe igbọran si. Ẹsin Kristi yoo so gbogbo awọn ti wọn ba gba ikọni rẹ pọ di ara kan. Erongba Jesu ni lati ba awọn eniyan laja pẹlu Ọlọrun ati laarin ara wọn. Ṣugbọn gbogbo aye lapapọ wa labẹ akoso Satani ọta Jesu ti o ga julọ. Iyinrere fun wọn ni ẹkọ ìgbé aye ti o yatọ patapata si iwa ati ifẹ ọkan wọn, wọn si dide ni iṣọtẹ si. Wọn korira iwa ailabawọn ti o fi ẹṣẹ wọn han ti o si ba wọn wi, wọn ṣe inunibini si awọn ti wọn ni ki wọn pa akọsilẹ mimọ ati otitọ rẹ mọ, wọn si pa wọn run. Ni ọna yii—nitori ti awọn otitọ nla rẹ n fa ikorira ati ija—ni a fi pe iyinrere ni idà. Ètò ti ko yeni ti o gba awọn olododo laaye lati jiya inunibini ni ọwọ awọn eniyan buburu fa iporuuru ọkan nla fun awọn ti wọn jẹ alailera ninu igbagbọ. Awọn miran ṣetan lati sọ igboya wọn ninu Ọlọrun nu nitori ti O gba awọn eniyan buburu laaye lati ṣe rere, nigba ti agbara ika wọn n fiya jẹ awọn ẹni rere ati eniyan mimọ ti o si n da wọn loro. A maa n beere, bawo ni Ẹni ti O jẹ olododo ati alaanu ti agbara rẹ ko lopin ṣe le fi aaye gba iru iwa aisotitọ ati ifiyajẹni yii. A ko ni ohunkohun i ṣe pẹlu ibeere yii. Ọlọrun ti fun wa ni ẹri ti o pọ to nipa ifẹ Rẹ, a ko si gbọdọ ṣe iyemeji nipa iwa rere Rẹ nitori pe a ko ni oye iṣọwọṣiṣẹ ipese Rẹ. Nigba ti O ri iyemeji ti yoo kọlu ọkan awọn ọmọ ẹyin Rẹ ni akoko okunkun ati idanwo, Olugbala sọ fun wọn wipe: “Ẹ ranti ohun ti Mo sọ fun yin, iranṣẹ ki i tobi ju oluwa rẹ lọ. Bi wọn ba ṣe inunibini si Mi, wọn yoo ṣe inunibini si yin pẹlu.” Johanu 15:20. Ìyà ti Jesu jẹ fun wa ju eyi ti eyikeyi ninu awọn atẹle Rẹ yoo jẹ lati ọwọ awọn eniyan buburu lọ. Awọn ti a pe lati fi ara da ijiya ati ijẹriku tilẹ n tẹle apẹẹrẹ Ọmọ Ọlọrun lasan ni.

“Ọlọrun ko fi ileri Rẹ jafara.” 2 Peteru 3:9. Ko gbagbe bẹẹ ni kò kọ awọn ọmọ Rẹ silẹ; ṣugbọn O gba awọn eniyan buburu laaye lati fi bi wọn ti jẹ nitootọ han, ki a ma baa tan ẹnikẹni ti o ba fẹ ṣe ifẹ Rẹ jẹ nipa wọn. Siwaju si, a n ju awọn olododo sinu ina ijiya ki a baa le fọ wọn mọ; ki apẹẹrẹ wọn le jẹ ki awọn miran o mọ itumọ igbagbọ ati iwabiọlọrun; ati ki iwa aiyẹsẹ wọn baa le jẹ ibawi fun awọn alaiwabiọlọrun ati alaigbagbọ.

Ọlọrun gba awọn eniyan buburu laaye lati ṣe rere ati lati fi ikorira wọn si Oun han ki gbogbo eniyan baa le ri otitọ ati aanu Ọlọrun ninu iparun wọn nigba ti wọn bá kún ago ẹṣẹ wọn. Ọjọ igbẹsan Rẹ n yara bọ kankan, nigba ti gbogbo awọn ti wọn ru ofin Rẹ ti won si fi iya jẹ awọn eniyan Rẹ yoo gba ere ti o tọ si iṣẹ wọn; nigba ti a o fi iya jẹ gbogbo iwa ika ati iwa aiṣododo tí a ṣe si awọn olootọ Ọlọrun gẹgẹ bi eyi ti a ṣe si Kristi funra Rẹ.

Ohun miran tun wa tí o yẹ ki awọn ijọ ode oni o fi iyè si. Aposteli Pọlu sọ wipe “gbogbo awọn ti yoo gbe igbesi aye iwabiọlọrun ninu Kristi Jesu yoo doju kọ inunibini.” 2 Timoti 3:12. Kini o wa ṣẹlẹ ti o fi dabi ẹnipe inunibini rẹwẹsi? Idi kan ṣoṣo ni wipe ijọ ti da ara pọ mọ agbekalẹ aye nitori naa kò ru àtakò sókè mọ. Ẹsin ti o wọpọ ni ode òni ko ni iwa pipe ati iwa mimọ ti o wa ninu igbagbọ Kristẹni ni akoko Kristi ati awọn apostoli. Nitori ẹmi ibadọrẹ pẹlu ẹṣẹ, nitori pe a ko naani awọn otitọ nla ti wọn wa ninu ọrọ Ọlọrun, nitori pe ẹmi iwabiọlọrun ko wọpọ mọ ninu ijọ, ni o fi dabi ẹnipe esin Kristẹni wa ni iṣọkan pẹlu aye. Ẹ jẹ ki isọji igbagbọ ati agbara ijọ akoko o wa, ẹmi inunibini yoo sọji, a o si tun ina inunibini tan.

3

Àkókò Òkùnkùn Ti Ẹmí

Apostoli Pọlu, ninu lẹta rẹ keji si awọn ara Tẹsalonika, sọ asọtẹlẹ nipa iyapa nla ti yoo yọri si idasilẹ agbara ijọ paadi. O sọ wipe ọjọ Kristi ki yoo de “ayafi ti iyapa ba kọkọ wá ná, ti a si fi ọkunrin ẹṣẹ ni han, ọmọ èbé; ẹni ti o tako, ti o si gbe ara rẹ ga ju gbogbo ohun ti a n pe ni Ọlọrun lọ tabi ti a n jọsin; to bẹẹ ti o joko bi Ọlọrun ninu tẹmpili Ọlọrun, ti o n fi ara rẹ han pe Ọlọrun ni oun.” Siwaju si, apostoli naa ki awọn arakunrin rẹ nilọ wipe “ohun ijinlẹ ẹṣẹ naa ti n ṣiṣẹ na.” 2 Tesalonika 2:3, 4, 7. Ani lati igba ibẹrẹ yẹn o ri awọn aṣiṣe ti yoo pese ọna silẹ fun idagbasoke ijọ paadi bi wọn ti n wọ inu ijọ.

Diẹdiẹ, ni bonkẹlẹ ati ni idakẹjẹ ni akọkọ, o wa n fi ara rẹ han ni gbangba bi o ti n ni okun si ti o si n gba akoso ọkan awọn eniyan, “ohun ijinlẹ ẹṣẹ” n tẹsiwaju ninu iṣẹ itanjẹ ati isọrọ odi rẹ. Ni aifiyesi, awọn aṣa ibọrisa wọ inu ijọ Kristẹni. Inunibini nla ti ijọ doju kọ labẹ ẹsin ibọrisa ká ẹmi ibarẹ ati iwani-iṣọkan pẹlu aye lọwọ kò fun igba diẹ. Ṣugbon bi inunibini ti dawọ duro, ti ẹsin Kristẹni wo inu gbọngan ati aafin awọn ọba, o kọ irẹlẹ Kristi ati awọn apostoli silẹ, o si gbe igberaga ati aṣehan awọn alufa ati alaṣẹ ibọrisa wọ; o fi ẹkọ ati aṣa eniyan rọpo aṣẹ Ọlọrun. Iyipada afẹnuṣe Constantine, ni ìbẹrẹ ọrundun kẹrin, fa ajọyọ nla; bayi ni aye ti a wọ ni aṣọ ododo, ṣe wọ inu ijọ. Bayi iṣẹ iwa ibajẹ yara dàgbà kánkán. Ẹsin ibọrisa di aṣẹgun nigba ti o dabi ẹnipe a ṣẹgun rẹ. Ẹmi rẹ ni o n ṣe akoso ijọ. A mu ikọni, aṣa, ati igbagbọ rẹ wọ inu igbagbọ ati ijọsin awọn atẹle Kristi.

Ibarẹ yii laarin ẹsin ibọrisa ati ẹsin Kristẹni ni o yọri si idagbasoke “ọkunrin ẹṣẹ” ti a sọtẹlẹ ninu asọtẹlẹ bi eyi ti o tako, ti o si gbe ara

ga ju Ọlọrun lọ. Ilana nla ẹsin eke naa jẹ titayọ agbara Satani—ami agbara rẹ lati joko lori itẹ lati ṣe akoso gẹgẹ bi ifẹ rẹ.

Ni igba kan ri, Satani sa ipa lati ba Kristi dọrẹ. O wa si ọdọ Ọmọ Ọlọrun ninu aginju idanwo, o fi gbogbo ijọba aye yii ati ogo wọn han-An, o si ṣe ileri lati fi gbogbo wọn fun Un bi yoo ba gba ọmọ alade okunkun ni ọga. Kristi ba adanniwo yii wi, O si fi ipa le e kuro. Ṣugbọn Satani maa n ṣe aṣeyọri daradara bi o ba gbe iru idanwo kan naa wa si ọdọ eniyan. Ijọ wa ojurere ati atilẹyin awọn ẹni nla aye lati le ri ọla ati èrè aye; nigba ti o ti kọ Kristi silẹ, o rọrun fun lati ṣe igbọran si aṣoju Satani— alufa Romu.

Ọkan lara awọn ẹkọ ti o gbajugbaja ninu ẹsin Romu ni wipe popu ni olori ti a le fi oju ri ninu ijọ Kristi, ti a fun ni agbara lori awọn bisọbu ati alufa ni gbogbo aye. Siwaju si, a fun popu ni orukọ Ọlọrun gan. A n pe e ni "Oluwa Ọlọrun Popu", a si sọ wipe ko le ṣe aṣiṣe. O n beere fun ijọsin gbogbo eniyan. Ohun kan naa ti Satani beere fun ni aginju idanwo naa ni o si n beere fun nipasẹ Ijọ Romu, ti ọpọ eniyan si ṣetan lati jọsin rẹ.

Ṣugbọn awọn ti wọn beru ti wọn si bu ọla fun Ọlọrun fọ esi si ìpe ọrun nija yii bi Kristi ṣe fesi fun ọta alarekereke naa: "Oluwa Ọlọrun rẹ nikan ni ki iwọ o fi ori balẹ fun, Oun nikan ṣoṣo si ni ki iwọ o sin." Luku 4:8. Ọlọrun ko sọ ohun ti o jọ ọ ninu ọrọ Rẹ wipe Oun yan eniyan kankan lati jẹ olori ijọ. Ikoni wipe popu jẹ ọga patapata tako awọn ikọni Iwe Mimọ. Popu ko le ni agbara kankan lori ijọ Kristi ayafi eyi ti o ba fi ipa gbà.

Awọn ẹlẹsin Romu n tẹsiwaju lati fi ẹsun ẹkọ odi ati mimọọmọ yapa kuro ninu ijọ tootọ kan awọn Protestant. Ṣugbọn awọn gan an ni ẹsun yii ba mu. Awọn ni wọn gbe asia Kristi silẹ ti wọn yago kuro ninu "igbagbọ ti a fi lelẹ fun awọn eniyan mimọ ni igba kan ṣoṣo." Juda 3.

Satani mọ daradara wipe Iwe Mimọ yoo ran awọn eniyan lọwọ lati da itanjẹ oun mọ yoo si jẹ ki wọn kọ oju ija si agbara oun. Ani ọrọ naa ni Olugbala araye lo lati doju kọ atako rẹ. Kristi lo apata otitọ ayeraye fun gbogbo ikọlu rẹ, ni wíwípé, "A ti kọwe rẹ." O lo ọgbọn ati agbara ọrọ naa lati tako gbogbo imọran Satani. Ki Satani to le ni akoso lori eniyan, ki o si fi idi aṣẹ ijọ paadi ti ó fi ipa gba agbara mulẹ, o nilati jẹ ki wọn jẹ ope ninu Iwe Mimọ. Bibeli yoo gbe Ọlọrun ga, yoo si fi eniyan ẹlẹran ara si ipo rẹ; nitori idi eyi a nilati fi awọn otitọ mimọ inu rẹ pamọ ki a si tẹ wọn rì. Ijọ Romu lo iru iṣọwọronu yii. Fun ọpọlọpọ ọdun o jẹ ohun ti ko ba ofin mu lati pin Bibeli kaakiri. A kan an nipa fun awọn eniyan lati maṣe ka Bibeli tabi ni i ninu ile wọn, awọn alufa ati olori ijọ oniwakiwa si n tumọ awọn ikọni rẹ lati gbe èké wọn lẹsẹ.

Bayi ni gbogbo eniyan ṣe fẹrẹ gba popu tan gẹgẹ bi aṣoju Ọlọrun lori ilẹ aye, ti a fun ni agbara lori ijọ ati ilu.

Nigba ti a ti mu ohun ti o n da irọ mọ kuro, Satani n ṣiṣẹ gẹgẹ bi ifẹ rẹ. Asọtẹlẹ kede wipe aṣẹ ijọ paadi yoo "rò lati yi akoko ati ofin pada." Danieli 7:25. Ko lọra lati ṣe iṣẹ yii. Lati le jẹ ki awọn ti a jere lati inu ẹsin ibọriṣa o ri arọpo fun ijọsin èrè, ati lati le jẹ ki ọpọ eniyan o gba ẹsin Kristẹni ni afẹnujẹ, a mu ijọsin èrè ati ohun iranti wọ inu ẹsin Kristẹni ni diẹdiẹ. Lẹyin-ọrẹyin, aṣẹ ajọ gbogboogbo fi idi ilana ibọriṣa mulẹ. Lati le pari iṣẹ ailọwọ yii, Romu gbero lati yọ aṣẹ keji, eyi ti o ka ijọsin ere leewọ, kuro ninu ofin Ọlọrun, o si pin ofin kẹwa si meji lati le jẹ ki iye rẹ ó pé.

Ẹmi ifohunṣọkan pẹlu ẹsin ibọriṣa ṣi ọna silẹ siwaju si lati kọ aṣẹ Ọrun silẹ. Satani, nipa lilo awọn adari ijọ ti ko ni ifọkansin, fọwọ ba ofin kẹrin pẹlu, wọn si gbiyanju lati kọ ọjọ Isinmi igba atijọ ni silẹ, ọjọ ti Ọlọrun bukun ti O si ya si mimọ (Jẹnẹsisi 2:2, 3), o wa gbe ọjọ ti awọn abọriṣa n pamọ gẹgẹ bi "ọjọ mimọ oòrùn" dipo rẹ. A ko bẹrẹ iyipada yii ni gbangba. Ni ọgọrun ọdun akọkọ, gbogbo Kristẹni ni wọn n pa ọjọ Isinmi tootọ mọ. Wọn jowu fun ọla Ọlọrun, pẹlu igbagbọ wipe ofin Rẹ ko ṣe e parẹ, wọn fi itara pa ilana mimọ rẹ mọ. Ṣugbọn pẹlu ọgbọn àrékérekè nla Satani ṣiṣẹ lati mu erongba rẹ ṣẹ nipasẹ awọn aṣoju rẹ. Ki a baa le pe akiyesi awọn eniyan si ọjọ Sunde, a pe e ni ọjọ ajọyọ ni àyajọ ajinde Kristi. A ṣe eto isin ni ọjọ naa; sibẹ a si n wo o gẹgẹ bi ọjọ igbafẹ, ti awọn eniyan si n ya ọjọ Isinmi si mimọ.

Lati pese ọna silẹ fun iṣẹ ti o fẹ ṣe, saaju wiwa Kristi, Satani mu ki awọn Ju o di ẹru wuwo le ori ọjọ Isinmi pẹlu awọn ofin inira wọn, wọn jẹ ki o nira lati pa a mọ. Ni isinsinyii, o ko ẹgan ba a gẹgẹ bi aṣa awọn Ju nipa lilo anfani ọna ti o fi jẹ ki a fi han ni ọna ti ko tọ. Nigba ti awọn Kristẹni n pa ọjọ Sunde mọ gẹgẹ bi ọjọ ajọdun, o dari wọn lati yan ọjọ Isinmi gẹgẹ bi ọjọ awẹ, ọjọ ibanujẹ ati ọjọ ìkorò, lati le fi ikorira wọn si ẹsin awọn Ju han.

Ni ibẹẹrẹ ọrundun kẹrin, ọba Constantine pa aṣẹ ti o sọ ọjọ Sunde di ọjọ ajọyọ kaakiri ilẹ ijọba Romu. Awọn abọriṣa ninu ijọba rẹ n bọwọ fun ọjọ oorun, awọn Kristẹni si n bọwọ fun pẹlu; erongba ọba naa ni lati so awọn ohun ti wọn tako ara wọn ninu ẹsin ibọriṣa ati ẹsin Kristẹni pọ ṣe ọkan. Awọn bisọbu ti wọn jẹ ọlọkanjuwa, ti wọn si n wa agbara ni wọn rọ ọ lati ṣe eyi, wọn rò ó wipe bi awọn Kristẹni ati awọn abọriṣa ba n pa ọjọ kan naa mọ, yoo mu ki awọn abọriṣa o gba ẹsin Kristẹni yoo si jẹ ki ogo ati agbara ijọ o pọ si. Ṣugbọn nigba ti a n jẹ ki awọn Kristẹni ti wọn bẹru Ọlọrun o ri ọjọ Sunde gẹgẹ bi ọjọ mimọ, wọn si n ri ọjọ Isinmi tootọ bi eyi ti o mọ si Oluwa, wọn si n ya a si mimọ ni igbọran si ofin kẹrin.

Atanniję nla naa koi tii pari iṣẹ rẹ. O pinu lati ko gbogbo Kristẹni si abẹ akoso rẹ, ki o lo agbara rẹ lori wọn nipasẹ aṣoju rẹ, alufa onigberaga ni, ti o n pe ara rẹ ni aṣoju Kristi. O ṣe aṣeyọri ninu ete rẹ nipasẹ awọn abọrisa ti ko ni iyipada ọkan tan, awọn alufa ọlọkanjuwa, ati awọn ọmọ ijọ ti wọn fẹran aye. A pe awọn ipade igbimọ lati igba de igba nibi ti awọn ijoye ijọ lati gbogbo aye ti pejọ pọ. Ninu awọn ipade wọn, a n tẹ ọjọ Isinmi ti Ọlọrun funra Rẹ dá rì, nigba ti a si n gbe ọjọ Sunde ga. Bayi ni ọjọ ajọyọ awọn abọrisa ṣe wa di ọjọ ti a n bu ọla fun gẹgẹ bi agbekalẹ Ọlọrun, a n pe ọjọ Isinmi ti inu Bibeli ni ami ẹsin Ju, a si n fi awọn ti wọn pa a mọ gegun.

Oluyapa nla naa ṣe aṣeyọri ni gbigbe ara rẹ ga "kọja gbogbo ohun ti a n pe ni Ọlọrun tabi ti a n jọsin." 2 Tẹsalonika 2:4. O ni igboya lati yi ilana kan ṣoṣo ninu ofin Ọlọrun eyi ti o fi Ọlọrun otitọ ati alaaye han gbogbo eniyan ni kedere pada. A fi Ọlọrun han ninu ofin kẹrin gẹgẹ bi Ẹlẹda ọrun ati aye, eyi si ni o ya A sọtọ laarin awọn ọlọrun èké. A ya ọjọ keje sọtọ gẹgẹ bi ọjọ Isinmi fun eniyan ni ayajọ iṣẹ dida. A pète rẹ lati le jẹ ki Ọlọrun o wà ninu iyè eniyan nigba gbogbo gẹgẹ bi orisun ẹmi ati ohun ti o yẹ ki a bọwọ fun ti o si yẹ ki a maa jọsin. Satani n ṣe akitiyan lati yi eniyan pada kuro ninu igbọran wọn si Ọlọrun ati si ofin Rẹ; nitori naa o lo agbara rẹ ni ọna pataki lati tako ofin naa, eyi ti o tọka si Ọlọrun gẹgẹ bi Ẹlẹda.

Ni akoko yii awọn Protestant n sọ wipe ajinde Kristi ni ọjọ Sunde ni o sọ ọ di ọjọ Isinmi awọn Kristẹni. Ṣugbọn ko si ẹri lati inu Bibeli. Kristi tabi awọn apostoli Rẹ ko bu iru ọla yii fun ọjọ naa. Lilo ọjọ Sunde gẹgẹ bi aṣa Kristẹni ní ipilẹṣẹ rẹ ninu "ohun ijinlẹ ẹṣẹ" ni (2 Tẹsalonika 2:7), eyi ti o ti bẹrẹ iṣẹ rẹ ani ni akoko Pọlu. Nibo ati nigbawo ni Oluwa sọ ijọ paadi yii di ọmọ? Iru alaye ti o munadoko wo ni a le ṣe fun iyipada ti Iwe Mimọ ko fi ọwọ si? Ni ọrundun kẹfa ijọ paadi ti fi ẹsẹ mulẹ daradara. Ibukojo agbara rẹ wa ninu ilu alaṣẹ ni, a si sọ wipe biṣọbu ni olori fun gbogbo ijọ patapata. Ẹsin ibọrisa fi àyè silẹ fun ijọ paadi. Dragoni naa fun ẹranko naa ni "agbara rẹ, ati ibujoko rẹ, ati aṣẹ nla." Ifihan 13:2. Bayi ni ifiyajẹni fun ọtalelẹgbẹfa (1260) ọdun lati ọwọ ijọ paadi ti a sọtẹlẹ ninu iwe Danieli ati Ifihan ṣe bẹrẹ. Danieli 7:25; Ifihan 13:5—7. A wa fi ipa mu awọn Kristẹni lati yan, boya lati kọ iṣotitọ wọn silẹ ki wọn si gba aṣa ati ijọsin ijọ paadi, tabi ki wọn lo igbesi aye wọn ninu ẹwọn tabi ki wọn padanu ẹmi wọn ninu ohun ìdánilóró, ninu ina, tabi pelu aaké abẹnilori. Ọrọ Jesu wa wa si imuṣẹ wipe: "Awọn obi, ati arakunrin, ati ará ati ọrẹ yoo si fi yin han; wọn o si mu ki wọn ṣe iku pa diẹ ninu yin. Gbogbo eniyan yoo si korira yin nitori orukọ Mi." Luku 21:16, 17. Inunibini wa si ori awọn olootọ pẹlu ibinu gbigbona ti o ju ti tẹlẹ lọ, gbogbo aye si di oju ija nla. Fun ọpọlọpọ ọdun awọn ijọ Kristi

ri aabo ninu ibi ìfarasin ati ibi ìhamọ. Woli naa wipe: “Obinrin naa salọ sinu aginju, nibi ti Ọlọrun ti pese aye silẹ fun, ki a le bọ ọ nibẹ fun ọtalelẹgbẹfa (1260) ọjọ.” Ifihan 12: 6.

Igoke Ijọ Romu si ipo agbara jẹ ibẹrẹ Àkókò Òkùnkùn. Bi agbara rẹ ti n pọ si, bẹẹ ni okunkun naa ṣe n dudu si. A gbe igbagbọ kuro ni ọdọ Kristi, ipilẹ tooto, si ọdọ popu ti Romu. Dipo ki wọn gbẹkẹle Ọmọ Ọlọrun fun idariji ẹṣẹ ati fun iye ainipẹkun, awọn eniyan n wo popu ati awọn alufa ati awọn aṣoju ti o fi aṣẹ fun. A kọ wọn wipe popu ni olubalaja wọn ni aye ati pe ko si ẹni ti o le de ọdọ Ọlọrun ayafi nipasẹ rẹ; ati wipe o duro ni ipo Ọlọrun si wọn, nitori naa, ki wọn ṣe igbọran si laiṣeyemeji. Iyapa kuro ninu agbekalẹ rẹ to ki a fi iya ti o lagbara julọ jẹ ara ati ọkan awọn ti wọn ba ṣẹ. Nipasẹ eyi ọkan awọn eniyan yi kuro ni ọdọ Ọlọrun wa si ọdọ awọn ika eniyan ti wọn ti ṣubu ti wọn si baku, ani si ọdọ ọmọ alade okunkun funra rẹ, ti o n lo agbara rẹ nipasẹ wọn. A fi ẹṣẹ han pẹlu aṣọ iwamimọ. Nigba ti a ba tẹ Iwe Mimọ rì, ti eniyan si n ri ara rẹ bi ẹni ti o ga julọ, ẹtan, itanjẹ, ati ẹṣẹ ti o buru julọ ni a o ri. Nipa gbigbe ofin ati aṣa eniyan soke, a ri iwa ibajẹ ti o saba maa n tẹle kikọ ofin Ọlọrun silẹ.

Akoko naa jẹ akoko ewu fun ijọ Kristi. Awọn olootọ ti n gbe ọpagun soke kere niye nitootọ. Bi o tilẹ jẹ wipe a ko fi otitọ silẹ laini olujẹri, sibẹ ni igba miran, a dabi ẹni pe èké ati ìgba asán gbọ yoo bori patapata, ati pe a o gba isin otitọ kuro ninu aye. Awọn eniyan gbagbe iyinrere, ṣugbọn a sọ afarawe ẹsin di pupọ, a wa di ẹru wuwo le awọn eniyan lori.

A kò kọ wọn lati wo popu gẹgẹ bi alagbawi nikan, ṣugbọn lati tun gbẹkẹle iṣẹ ara wọn fun imukuro ẹṣẹ. Irin ajo ẹsin, iṣẹ ironupiwada, ijọsin awọn ère, kíkọ ile ijọsin, ojúbọ, ati pẹpẹ, sisan owo nla si inu ijọ—awọn wọnyi ati ọpọlọpọ awọn ohun miran bẹẹ ni a fi n kọni lati ṣe lati lè tu ibinu Ọlọrun loju tabi lati le ri aanu Rẹ; a fi bi ẹnipe Ọlọrun dabi eniyan, ti n binu si ohun ti ko nilari, tabi ti a le fi ẹbun tabi iṣẹ ironupiwada tù lójú!

Laika iwa ẹṣẹ ti n gbilẹ kan si, ani laarin awọn adari Ijọ Romu, agbara rẹ n pọ si. Nigba ti ọrundun kẹjọ fẹrẹ ẹ pari, awọn atẹle popu sọ wipe lati akoko ibẹrẹ pẹpẹ ijọ ni awọn bisọbu Romu ti ni agbara ẹmi ti wọn n lo nisinsinyii. Lati fi idi ọrọ yii mulẹ, a ni lati wa ọna ti yoo fi ni aṣẹ; baba irọ si fun wọn ni èyi kánkán. Awọn ajẹjẹ ẹsin ṣe ayederu iwe atijọ kan. A ri awọn aṣẹ igbimọ kan ti a ko gbọ ri, ti wọn fi aṣẹ popu lori gbogbo aye mulẹ lati ibẹrẹ wa. Ijọ ti o ti kọ otitọ silẹ si yára kánkán lati gba itanjẹ yii.

Ọkan awọn olootọ perete ti wọn n kọle le ori ipilẹ tootọ (1 Korinti 3:10, 11) poruuru, wọn si ri idiwọ bi pàntí ẹkọ èké ṣe di iṣẹ naa lọwọ.

Bii awọn onkọle lori odi Jerusalẹmu ni àkókò Nehemaya, awọn miran ṣetan lati sọ wipe: “Agbara awọn ti n ru ẹrù dínkù, àlààa pupọ ni o wa, to bẹẹ ti awa ko fi le mọ odi naa.” Nehemaya 4:10. Agara dá wọn nitori ijakadi àtìgbàdégbà pẹlu inunibini, itanjẹ, ẹṣẹ, ati oniruuru idena ti Satani le pète lati fi di itẹsiwaju wọn lọwọ, ọkàn diẹ lara awọn onkọle ti wọn jẹ olootọ kaarẹ; wọn si yi pada kuro nibi ipilẹ tootọ nitori alaafia ati aabo fun dukia ati ẹmi wọn. Awọn miran kò rẹwẹsi nitori atako awọn ọta wọn, laiberu, wọn sọ pe: “Ẹ maṣe bẹru wọn: ẹ ranti Oluwa ti o tobi ti o si lẹru” (ẹsẹ 14); wọn si tẹsiwaju pẹlu iṣẹ naa, olukuluku pẹlu ida rẹ lẹgbẹẹ rẹ. Efesu 6:17.

Iru ẹmi ikorira ati atako si otitọ kan naa ni o n mi si awọn ọta Ọlọrun ni gbogbo igba, iru iṣọra ati iṣotitọ kan naa ni a n reti lati ọdọ awọn iranṣẹ Rẹ. Awọn ọrọ Kristi si awọn ọmọleyin Rẹ akoko si ni itumọ fun awọn atẹle Rẹ titi dé opin akoko: “Ohun ti Mo sọ fun yin ni Mo sọ fun gbogbo eniyan, Ẹ maa ṣọna.” Maku 13:37.

O dabi ẹnipe okunkun naa n gbilẹ si. Ijọsin ere tubọ n di gbajúgbajà si. A n tan abẹẹla niwaju awọn ère a si n gbadura si wọn. Awọn àṣà asán ti ko tọ gbilẹ kan. Igbagbọ ninu ohun asan n dari ọkan awọn eniyan to bẹẹ gẹẹ ti o fi dabi ẹnipe ko si aaye fun ironu mọ. Niwọn ìgbà tí awọn alufa ati biṣọbu funra wọn jẹ olufẹ faaji, onifẹkufẹ ara, ati oniwaibaje, o ni lati daniloju wipe awọn eniyan ti n wo wọn fun itọsọna yoo tẹri sinu aimọkan ati iwa ibaje.

Ijọ paadi tun gbe igbesẹ miran ninu iwa igberaga ni ọrundun kọkanla nigba ti Popu Gregory VII kede wipe Ijọ Romu wa ni ailabuku. Lara awọn ọrọ ti o sọ ni wipe ijọ ko ṣe aṣiṣe rí bẹẹni ko si le ṣe aṣiṣe, bi Iwe Mimọ ti sọ. Ṣugbọn ẹri Iwe Mimọ ko ba ọrọ yii mu. Alufa agberaga naa sọ wipe ohun ni agbara lati yọ awọn ọba loye, o tun sọ wipe ko si ẹnikẹni ti o le yi ọrọ ti oun ba sọ pada, ṣugbọn ẹtọ oun ni lati yi ipinu gbogbo awọn iyoku pada.

A ri apejuwe iwa ika ẹni ti o n sọ wipe oun ko le baku yii ni bi o ti ṣe si Henry IV, ọba Germany. A kede wipe a lé ọba yii kuro ninu ijọ ati pe a tun rọ ọ loye nitori ti o gbero lati ṣe aigbọran si aṣẹ popu. Ẹru ba a nigba ti awọn ijoye rẹ, awọn ti aṣẹ popu n ti lẹyin lati ṣọtẹ si, kọ ọ silẹ wọn si n dun kukulaja mọ; Henry ri wipe o ṣe pataki ki oun ba Romu laja. Pẹlu iyawo ati iranṣẹ rẹ kan ti o jẹ olootọ, o la oke Alps kọja ni akoko yinyin, ki o baa le rẹ ara rẹ silẹ niwaju popu. Nigba ti o de ile iṣọ, Gregory ti kuro nibẹ, o lọ si gbọngan ti o wa ni ita, laisi eṣọ rẹ nibẹ, ninu otutu yinyin, laibo ori ati laiwọ bata, pẹlu aṣọ kan lasan, o duro de aṣẹ lati pe e wá siwaju rẹ. À fi igba ti o duro nibẹ, pẹlu awẹ ti o n jẹwọ ẹṣẹ fun ọjọ mẹta, ni alufa naa tó gbà lati fun ni idariji. Pẹlupẹlu, o ṣe eyi lori wipe ọba naa a duro de aṣẹ popu ki o to le wọ

aṣọ igunwa rẹ tabi lati lo aṣẹ ọba. Gregory ti inu rẹ dun pẹlu iṣẹgun yii, fọnnu wipe ojuṣe oun ni lati ṣe igberaga awọn ọba rọ.

Iyatọ ti pọ to laarin igberaga nla alufa yii ati iwapẹlẹ ati ọkan tutu Kristi ti O fi ara Rẹ han bi ẹni ti n bẹbẹ ni ẹnu ilẹkun ọkan eniyan lati wọle, ki Oun lè wọle lati mu ayọ ati alaafia wa, ti O tun kọ awọn ọmọ ẹyin Rẹ pe: "Ẹnikẹni ti o ba fẹ ṣe olori ninu yin, ẹ jẹ ki o maa ṣe ọmọ ọdọ yin." Matiu 20:27.

Awọn ọdun tí n yí lọ n ri bi aṣiṣe ti n pọ si loorekoore ninu awọn ikọni ti Romu n gbe sita. Ani ṣaaju ki a to fi idi ijọ paadi mulẹ a n fiyesi ikọni awọn alarojinlẹ ti wọn jẹ abọrisa wọn sì n ni ipa ninu ijọ. Ọpọlọpọ ti wọn sọ wipe wọn ti yipada ni wọn si dirọ mọ igbagbọ ero abọrisa wọn, kìí si i ṣe wipe wọn n tẹsiwaju lati kẹkọ rẹ nikan, ṣugbọn wọn tun n fi n kọ awọn miran gẹgẹ bi ọna lati fikun ipa wọn laarin awọn abọrisa. Bayi ni awọn aṣiṣe nla ṣe wọ inu igbagbọ Kristẹni. Eyi ti o gbajugbaja ninu wọn ni igbagbọ wipe a bi eniyan pẹlu aiku ati wipe o mọ ohun ti o n ṣẹlẹ ninu ipo oku. Ikọni yii ni o jẹ ipilẹ lori eyi ti Romu gbe gbigbadura nipasẹ awọn eniyan mimọ ati ijọsin Maria Wundia le lori. Nibi ni ẹkọ èké nipa ijiya ayeraye fun awọn ti ko ronupiwada, eyi ti a tete mu wọ inu ikọni igbagbọ ijọ paadi ti jade wa.

Eyi pèsè ọna silẹ lati mu agbekalẹ ibọrisa miran, eyi ti Romu pè ní ibi idaloro wọle, o si n lo o lati dẹruba ọgọọrọ awọn eniyan ti wọn jẹ alaimọkan ti wọn ṣetan lati gba ohunkohun gbọ. Ẹkọ eke yii kọni wipe ibi idaniloro kan wa, nibi ti awọn ọkan ti ko yẹ fun ijiya ainipẹkun ti n jiya fun ẹṣẹ wọn, nibẹ si ni a o ti gbà wọn si ọrun nigba ti a ba ti fọ wọn mọ kuro ninu àbawọn wọn.

Romu tun nilo irọ miran lati le jẹ ere lati ara ibẹru ati iwa ẹṣẹ awọn atẹle rẹ. Ikọni nipa ìgba ẹṣẹ laaye ni o ṣe iṣẹ eyi. A ṣe ileri imukuro ẹṣẹ patapata fun awọn ẹṣẹ atẹyinwa, ti isisinyii, ati ti ọjọ iwaju, pẹlu idasilẹ kuro ninu irora ati ijiya ti wọn mu wa fun gbogbo awọn ti yoo kopa ninu ogun alufa naa lati fikún ilẹ ijọba rẹ, lati fiya jẹ awọn ọta rẹ, tabi lati pa awọn ti wọn ba kọ aṣẹ ẹmi rẹ silẹ run. A tun kọ awọn eniyan wipe nipa sísan owó sinu ijọ wọn le gba ara wọn kuro lọwọ ẹṣẹ, ki wọn tun gba ọkan awọn ọrẹ wọn ti wọn ti kú ti wọn wà ninu ina idaniloro silẹ. Nipasẹ ọna yii ni Romu gba lati fi ọrọ kun inu ile iṣura rẹ ti o si ri ọna lati jẹ ki awọn ti wọn pe ara wọn ni aṣoju Ẹni ti ko ri ibi ti yoo gbe ori Rẹ le o gbe igbe aye ọrọ, ọla, ati ẹṣẹ.

Ilana Ounjẹ Alẹ Oluwa ti Iwe Mimọ gbekalẹ ni a fi irubọ mass ti ibọrisa rọpo. Awọn alufa ijọ paadi n ro pe pẹlu ìkùnsínú wọn ti ko nitumọ, wọn le yi akara ati waini lasan pada di "ara ati ẹjẹ Kristi." Pẹlu isọrọ odi agberaga wọn n sọ ọ nigbangba wipe wọn ni agbara lati da Ọlọrun, Ẹlẹda ohun gbogbo. Lori ijiya iku, a fẹ ki awọn Kristẹni o jẹwọ

igbagbọ wọn ninu ẹkọ èké buburu ti n ri Ọrun fín yii. Ọpọlọpọ awọn ti wọn kọ ni a dáná sun.

Ni ọrundun kẹtala, a da ẹka ti o buru julọ ninu ijọ paadi silẹ—Àjọ ti n wàdí ohun ti eniyan gbagbọ. Ọmọ alade okunkun ṣiṣẹ pẹlu awọn olori ijọ paadi. Satani ati awọn angẹli rẹ dari ọkan awọn eniyan buburu ninu ipade ikọkọ wọn, nigbati angẹli Ọlọrun ti a ko ri duro laarin wọn, o n ṣe akọsilẹ ti o banilẹru nipa òfin ìkà wọn ti o si n kọ itan awọn iṣẹlẹ ti wọn buru ju ohun ti oju eniyan le ri lọ silẹ. “Babiloni nla naa mu ẹjẹ awọn eniyan mimọ yó.” Ara ẹgbẹẹgbeje awọn ajẹriku ti a pa n kigbe si Ọlọrun fun igbẹsan lori agbara apẹyinda yii.

Ijọba popu di abaṣẹwaa ninu aye, olotu ijọba ati awọn ọba n tẹriba fun aṣẹ alufa Romu. O dabi ẹnipe atubọtan eniyan fun aye yii aye ti n bọ wà labẹ àkóso rẹ. Fun ọpọlọpọ ọdun ọgọọrọ awọn eniyan n tẹwọ gba awọn ikoni rẹ laironu, wọn n fi tọwọtọwọ tẹle awọn ilana rẹ, gbogbo eniyan si n jumọ n bọwọ fun awọn ọjọ ajọyọ rẹ. A bu ọla fun awọn alufa rẹ a si n fun wọn ni ẹbun ni àkóyawọ. Lati igba yẹn ijọ Romu ko de ipò iyi, ọla, ati agbara yii mọ.

Ṣugbọn “ọsan ijọ paadi ni òru araye.” Iwe Mimọ di ohun ajeji, ki i ṣe si awọn eniyan nikan, ṣugbọn si awọn alufa pẹlu. Bii ti awọn Farisi ti ìgbàa nì, awọn olori ijọ paadi korira imọlẹ ti yoo fi ẹṣẹ wọn han. Nigba ti a ti mu ofin Ọlọrun, odiwọn ododo kuro, wọn n lo agbara laisi idaduro, wọn n dẹṣẹ laisi ikalọwọko. Ẹtan, ojukokoro, ati inakuna gba ilẹ kan. Awọn eniyan ko bẹru lati da ẹṣẹ eyi ti yoo fun wọn ni ọrọ tabi ipo. Aafin popu ati awọn alufa da ibi ti a ti n ṣe iṣekuṣe ti o buru jai. Diẹ lara awọn popu jẹbi awọn iwa ọdaran ti wọn bínínínú débi wipe awọn adari ilu ṣe akitiyan lati rọ awọn ijoye ijọ wọnyi loye gẹgẹ bi oniwa ibajẹ ti a ko le fi ara da. Fun ọpọlọpọ ọdun Europe ko ni idagbasoke ninu ẹkọ, iṣẹ ọnà, tabi ọlaju. Arun ẹgbà iwa ati ti ọpọlọ dé ba ẹsin Kristẹni.

Ipo ti aye wa labẹ agbara Romu jẹ imuṣẹ ti o lẹru ti o si peye fun awọn ọrọ woli Hosea: “Awọn eniyan Mi n ṣegbe nitori ti wọn ko ni imọ: nitori ti iwọ kọ imọ silẹ, Emi yoo kọ ọ silẹ pẹlu: . . . nitori ti iwọ ti gbagbe ofin Ọlọrun rẹ, Emi yoo gbagbe awọn ọmọ rẹ pẹlu.” “Ko si otitọ, tabi aanu, tabi imọ Ọlọrun ninu ilẹ naa. Nipa ibura, ati irọ, ati ipaniyan, ati olè jija, ati agbere ṣiṣe, wọn fọn sita, ti ẹjẹ si n kan ẹjẹ.” Hosea 4:6,1, 2. Eyi ni o maa n jẹ atubọtan kikọ ọrọ Ọlọrun silẹ.

4

Awọn Waldenses

Ninu okunkun ti ó bo aye mọlẹ ni akoko gigun tí ijọ paadi fi ṣe akoso, ina otitọ kò ku tan patapata. Ni gbogbo igba, Ọlọrun maa n ni awọn olujẹri—awọn ti wọn mu igbagbọ ninu Kristi gẹgẹ bi alagbawi kan ṣoṣo laarin Ọlọrun pẹlu eniyan lọkunkundun, ti wọn gba Bibeli gẹgẹ bi odiwọn fun igbesi aye, ti wọn si bọwọ fun ọjọ Isinmi tootọ. Arọmọdọmọ ko le mọ ohun ti ayé ní nipasẹ awọn eniyan wọnyi. A pe wọn ni ẹlẹkọ odi, a ṣe atako erongba wọn, a sọ ọrọ buburu nipa iwa wọn, a fi ipa tẹ akọsilẹ wọn rì, a ṣe afihan wọn ni ọna ti ko tọ, tabi ki a pa wọn run. Sibẹ wọn duro gbọin, lati iran de iran, wọn pa igbagbọ mọ ninu ailabawọn rẹ, gẹgẹ bi ohun ajogunba mimọ fun iran ti n bọ.

A kọ itan awọn eniyan Ọlọrun ni akoko okunkun ti o tẹle iṣakoso Romu si ọrun, bi o tilẹ jẹ wipe wọn ko ni aaye ti o pọ ninu akọsilẹ eniyan. Akọsilẹ perete ni a le ri nipa igbesi aye wọn, ayafi eyi ti a ri ninu ifẹsunkan awọn ti n ṣe inunibini si wọn. Iwa Romu ni lati pa gbogbo akọsilẹ awọn ti ko gba ikọni tabi aṣẹ rẹ rẹ. O n wọna lati pa ohunkohun ti o ba jẹ mọ ẹkọ òdì run, i baa jẹ eniyan tabi akọsilẹ. Fifi iyemeji han tabi bibeere ibeere lori aṣẹ awọn ikọni ijọ paadi to lati mu ni padanu ẹmi ẹni i baa jẹ ọlọrọ tabi talaka, ẹni giga tabi ẹni rirẹlẹ. Romu tun ṣe akitiyan lati pa gbogbo akọsilẹ iwa ika rẹ si awọn ti wọn tako o run. Igbimọ ijọ paadi pa aṣẹ wipe ki a sọ gbogbo iwe ati akọsilẹ ti wọn ba ni iru akọsilẹ bayi sinu ina. Ṣaaju ki a to ṣe ẹrọ itẹwe sita, awọn iwe kere niye, wọn tun wa ni ọna ti a ko fi le pa wọn mọ; nitori naa iwọnba ohun perete ni a le ṣe lati di awọn atẹle Romu lọwọ lati gbe erongba wọn jade.

Ko si ijọ kankan ni arọwọto aṣẹ Romu ti a fi silẹ fun igba pipẹ lati jẹ igbadun ominira ẹri ọkan. Lọgan ti ijọ paadi gba agbara, ó na ọwọ rẹ lati ṣe ipalara fun awọn ti wọn kọ lati gba aṣẹ rẹ, ni meni meji, awọn ijọ si n tẹriba fun aṣẹ rẹ.

Ni Great Britain ẹsin Kristẹni ti igba atijọ tete fi ẹsẹ mulẹ. Iyinrere ti awọn ara Britain gba ni ọrundun kini kò ni abawọn iyapa Romu. Inunibini lati ọdọ awọn ọba abọrisa, ti o de awọn ilẹ jijin wọnyi nikan ni ẹbun ti awọn ijọ akọkọ ni Britain gba lọwọ Romu. Ọpọlọpọ awọn Kristẹni ti wọn n sa fun inunibini ni England ri aabo ni Scotland; lati ibẹ ni a ti gbe otitọ lọ si Ireland, wọn si fi ayọ gba a ni gbogbo awọn orilẹ ede wọnyi.

Nigba ti awọn Saxons kọlu awọn Britain, ẹsin ibọrisa gba àkóso. Awọn aṣẹgun korira ki awọn ẹrú wọn o kọ wọn, eyi mu ki awọn Kristẹni o salọ si aarin awọn oke ati aginju. Sibẹ imọlẹ, ti o fi ara pamọ fun igba diẹ, tẹsiwaju lati tan. Ni ọgọrun ọdun lẹyin eyi, ni Scotland, itansan rẹ mọlẹ de awọn ilẹ jijinna réré. Columba olufọkansin ati awọn alabaṣiṣẹpọ rẹ wa lati Ireland, wọn ko awọn onigbagbọ ti wọn fọn kaakiri mọra si erekuṣu Iona, ibujoko iṣẹ ijere ọkan rẹ. Ẹni ti o n pa ọjọ Isinmi Bibeli mọ wà lara awọn ajiyinrere wọnyi, bayi ni otitọ yii ṣe wọ aarin awọn eniyan naa. A da ile-iwe silẹ ni Iona, nibi ti awọn ajere ọkan ti jade lọ si Scotland ati England, ani lọ si Germany, Switzerland, ani titi de Italy.

Ṣugbọn Romu ti kọ oju rẹ si Britain, o si ti pinu lati mu u wa si abẹ iṣakoso rẹ. Ni ọrundun kẹfa, awọn ajere ọkan rẹ ṣiṣẹ ijere ọkan awọn Saxons ti wọn jẹ abọrisa. Awọn agberaga ti ko laju yii gba wọn pẹlu oju rere, wọn si jẹ ki ọpọlọpọ wọn o gba igbagbọ Romu. Bi iṣẹ naa ti n tẹsiwaju, awọn adari ijọ paadi ati awọn ti wọn yipada wa ṣe alabapade awọn Kristẹni ti wọn gba igbagbọ igba atijọ. Wọn yatọ si ara wọn patapata. Awọn kan jẹ onirẹlẹ, olootọ, ti ìwà, ikọni, ati iṣesi wọn si ba Iwe Mimọ mu, nigba ti awọn keji fi aimọkan, iwuga ati igberaga ẹsin popu han. Awọn aṣoju Romu paṣẹ ki awọn ijọ Kristeni wọnyi o tẹriba fun aṣẹ popu. Awọn ara Britain fi irẹlẹ dahun wipe wọn nifẹ lati fẹran gbogbo eniyan, ṣugbọn popu ko ni ẹtọ si ipo ti o ga julọ ninu ijọ, ati wipe wọn a fun ni itẹriba ti o yẹ fun gbogbo atẹle Kristi. Ọpọlọpọ akitiyan ni a ṣe lati le ri wipe wọn ṣe igbọran si Romu; ṣugbọn awọn Kristẹni onirẹlẹ, ti ẹnu yà nitori igberaga ti awọn aṣoju Romu fihan yii, dahun pẹlu iduroṣinṣin wipe wọn ko mọ oluwa miran ayafi Kristi. Ni bayii ẹmi ijọ paadi nitootọ wa fi ara han. Adari Romu sọ wipe: “Bi ẹ ko ba ni gba awọn ara ti wọn mu alaafia wa fun yin, ẹ yoo gba awọn ọta ti yoo wa ko ogun ja yin. Bi ẹ ko ba ni da ara pọ mọ wa lati fi ọna iye han awọn ara Saxon, ẹ yoo gba pasan iku lati ọdọ

wọn.” Eyi ki i ṣe ihalẹ lasan. Ogun, iditẹ ati ẹtan ni a lo lati ṣe atako si awọn ẹlẹri si igbagbọ Bibeli wọnyi, titi ti a fi pa awọn ijọ Britain run, tabi ti a fi fi ipa mu wọn lati tẹriba fun aṣẹ popu.

Fun ọpọlọpọ ọdun awọn agbajọ Kristẹni kan wa ti wọn ko nipa ninu iwa ibajẹ Romu ninu awọn ilẹ ti aṣẹ Romu ko de. Ẹsin ibọrisa ni o yi wọn ka, bi ọjọ si ti n lọ wọn kopa ninu awọn aṣiṣe rẹ; ṣugbọn wọn gba Bibeli gẹgẹ bi odiwọn igbagbọ, wọn si gbagbọ ninu ọpọlọpọ otitọ to wa ninu rẹ. Awọn Kristẹni wọnyi gbagbọ wipe ofin Ọlọrun duro titi lae wọn si pa ọjọ Isinmi ofin kẹrin mọ. Awọn ijọ ti wọn si dirọ mọ igbagbọ ati iṣesi yii wa ni Central Africa, ati awọn Armenia ni Asia.

Ṣugbọn laarin awọn ti wọn kọju ija si ijẹgaba agbara popu, awọn Waldenses duro tayọ. Ninu ilẹ naa ti ẹsin popu fi ibujoko rẹ si, nibẹ ni a ti kọju ija si èké ati iwa ibajẹ rẹ julọ. Fun ọpọ ọdun awọn ijọ Piedmont wà ni ominira; ṣugbọn àkoko dé lẹyin-ọrẹyin ti Romu pọn-ọn ni dandan fun wọn lati tẹriba fun oun. Lẹyin ti wọn koju ija si iwa onroro rẹ ṣugbọn ti o jasi pabo, awọn adari ijọ wọnyi fi ilọra tẹriba fun agbara ti o dabi ẹnipe gbogbo aye n fi ori balẹ fun. Ṣugbọn awọn kan wa ti wọn kọ lati tẹriba fun aṣẹ popu tabi bisọbu. Wọn pinnu lati ṣe igbọran si Ọlọrun ati lati duro ninu iṣotitọ ati iwa mimọ igbagbọ wọn. Ipinya ṣẹlẹ. Awọn ti wọn tẹle igbagbọ atijọ wá fà sẹyin; awọn miran kọ òkè Alps, ilẹ abinibi wọn silẹ, wọn gbe ọpagun otitọ soke ni ilẹ ajeji; awọn miran lọ sinu awọn pẹtẹlẹ ti wọn farasin ati sinu apata laarin awọn oke, nibẹ wọn pa ominira wọn lati jọsin Ọlọrun mọ.

Igbagbọ ti awọn Kristẹni Waldenses gba ti wọn si fi kọni fun ọpọlọpọ ọdun yatọ patapata si ikọni èké ti Romu gbe sita. Igbagbọ esin wọn duro lori ọrọ Ọlọrun, ilana tootọ fun ẹsin Kristẹni. Ṣugbọn awọn aroko onirẹle wọnyẹn, ninu ibi aabo wọn ti o farasin, ti ko ri aaye yọju si araye, ti wọn ko ni ohun miran lati ṣe ju ki wọn maa ṣiṣẹ ojumọ wọn laarin awọn agbo aguntan ati ọgba ajara, ko ri otitọ funra ara wọn ni atako si igbagbọ ati ẹkọ èké ijọ apẹyinda. Igbagbọ won ki i ṣe eyi ti wọn ṣẹṣẹ gba lakọtun. Igbagbọ ẹsin wọn jẹ ajogunba lati ọdọ awọn baba wọn. Wọn jijadu fun igbagbọ ijọ apostoli,—”igbagbọ ti a fi lé awọn eniyan mimọ lọwọ lẹẹkan ṣoṣo.” Juda 3. “Ijọ ninu aginju,” olupamọ ohun alumọni otitọ ti Ọlọrun fifun awọn eniyan Rẹ lati fifun araye, ni ijọ Kristi tootọ, ki i si i ṣe alaṣẹ agberaga ti o joko lori itẹ ni olu ilu nla ijọba aye.

Kókó lara awọn ohun ti o mu ki ijọ tootọ o yapa kuro ni ọdọ Romu ni bi o ti ṣe ni ikorira fun ọjọ Isinmi inu Bibeli. Gẹgẹ bi asọtẹlẹ ti sọ ọ, agbara ijọ paadi yoo wo otitọ lulẹ. A tẹ ofin Ọlọrun mọlẹ ninu erupẹ, nigbati a n gbe aṣa ati iṣesi eniyan ga. A tètè fi ipa mu awọn ijọ ti wọn

wa labẹ akoso ijọ paadi lati bọwọ fun ọjọ Sunde gẹgẹ bi ọjọ mimọ. Laarin èké ati aṣiṣe ti o gbilẹ kan, ọpọlọpọ, ani laarin awọn eniyan Ọlọrun tootọ pẹlu, ni nnkan daru mọ loju debi pe nigba ti wọn n pa ọjọ Isinmi mọ, wọn ki i ṣe iṣẹ ni ọjọ Sunde pẹlu. Ṣugbọn eyi ko tẹ awọn adari ijọ paadi lọrun. Wọn pa á laṣẹ pe ki i ṣe wipe ki a bọwọ fun ọjọ Sunde nikan, ṣugbọn ki a ba ọjọ Isinmi jẹ pẹlu; wọn si ṣe idalẹbi fun ẹnikẹni ti o ba ni igboya lati bọwọ fun ni ọna ti o lagbara. Nipa sisa kuro labẹ agbara Romu nikan ni ẹnikẹni fi le pa ofin Ọlọrun mọ pẹlu alaafia.

Awọn Waldenses wa lara awọn eniyan akọkọ ni Europe ti wọn ni itumọ Iwe Mimọ ni ede wọn. Fun ọpọ ọdun ṣaaju iṣẹ Atunṣe, wọn ni ẹda Bibeli ti a fi ọwọ kọ ni ede abinibi wọn. Wọn ni otitọ ni ailabawọn, eyi si jẹ ki a fi oju si wọn lara gẹgẹ bi awọn ti a n korira ti a si n ṣe inunibini si. Wọn sọ wipe Ijọ Romu ni Babiloni apẹyinda ti iwe Isọtẹlẹ, pẹlu ewu lori ẹmi wọn, wọn duro lati kọju ija si awọn iwa ibajẹ rẹ. Labẹ inunibini ọlọjọgbọọrọ, awọn kan fa sẹyin ninu igbagbọ wọn, wọn si n fi awọn kókó ẹkọ inu rẹ silẹ diẹdiẹ, awọn yoku di otitọ mu ṣinṣin. Ni gbogbo àkókò okunkun ati ifasẹyin yii, awọn Waldenses kan wà ti wọn kọ lati gba aṣẹ Romu, ti wọn ko gba titẹriba fun ère nitori ti o jẹ ibọriṣa, ti wọn si pa ọjọ Isinmi tootọ mọ. Labẹ ìjì atako líle, wọn pa igbagbọ wọn mọ. Bi o tilẹ jẹ wipe a fi ọkọ Savoyard gun wọn, ti a si fi ina Romu sun wọn, wọn duro nitori ọrọ Ọlọrun ati fun iyi Rẹ laibẹru.

Awọn Waldenses ri aabo lẹyin ibi aabo awọn oke giga—ibi aabo fun awọn ti a n ṣe inunibini si ti a si n fi iya jẹ ni gbogbo igba. Imọlẹ otitọ n tan nibi laarin okunkun Igba Ojú Dúdú. Nibi, awọn ẹlẹri fun otitọ di igbagbọ atijọ mu fun ẹgbẹrun ọdun. Ọlọrun pèsè ibi aabo ẹlẹru fun awọn eniyan Rẹ, eyi ti o yẹ fun otitọ nla ti a fi le wọn lọwọ. Si awọn olootọ ti a le kuro ni ilu wọnyi, awọn oke jẹ ami ododo Ọlọrun ti a ko le ṣi nidi. Wọn tọka awọn ọmọ wọn si awọn oke giga ti ogo wọn ko yipada, wọn a sọ nipa Ẹni ti ko ni ayidayida tabi ojiji iyipada, ti ọrọ Rẹ wa titi lae bi awọn òkè ainipẹkun. Ọlọrun tẹ awọn oke dó, O si fi okun ṣe ikẹ wọn; ko si ọwọ naa, ayafi ti Agbara Ainipekun ti o le ṣi wọn kuro ni ipo wọn. Bẹẹ gẹgẹ ni o ṣe gbe ofin Rẹ kalẹ, ipilẹ ijọba Rẹ ni ọrun ati ni aye. Ọwọ eniyan le to awọn eniyan bii tirẹ, ki o si pa wọn; ṣugbọn ọwọ naa a le fa awọn oke tu lati ipilẹ wọn, ki o si sọ wọn si inu okun, ni ọna kan naa ti o fi le yi ilana kan ninu ofin Jehofa pada, tabi ki o pa ọkan lara awọn ileri Rẹ fun awọn ti wọn ba ṣe ifẹ Rẹ rẹ. Ninu iṣotitọ wọn si ofin Rẹ, awọn iranṣẹ Ọlọrun nilati duro gbọin bi awọn oke ti ko le yi pada.

Awọn oke ti wọn daabo bo afonifoji wọn jẹ ẹri atigbadegba si agbara Ọlọrun lati ṣẹda, ati idaniloju ti ko le baku nipa idaabobo Rẹ.

Awọn arinrinajo kọ lati fẹran awọn ami ti wọn fi ara sin wọnyi nipa iwapẹlu Jehofa. Wọn ko ṣe aroye nitori inira wọn; wọn ko wa ni awọn nikan laarin awọn oke ti wọn dakẹrọrọ. Wọn dupẹ lọwọ Ọlọrun wipe O fun wọn ni aabo kuro lọwọ ibinu ati iwa onroro eniyan. Inu wọn dun nitori ominira wọn lati jọsin niwaju Rẹ. Ni ọpọ igba ti ọta wọn ba lé wọn, agbara awọn oke maa n jẹ aabo ti o daju. Lati ori awọn gegele okuta wọn kọ orin iyin si Ọlọrun, awọn ẹgbẹgun Romu ko si le pa orin ọpẹ wọn lẹnu mọ.

Ifọkansin awọn atẹle Kristi wọnyi jẹ eyi ti o mọ, ti ko ni abula, ti o si gbona. Ẹkọ otitọ niye lori loju wọn ju ilẹ ati ile, ọrẹ, ojulumọ, ani ju ẹmi funra rẹ lọ. Wọn n fi tọkantọkan wá lati tẹ awọn ikọni wọnyi mọ ọkan awọn èwe wọn. A n fi Iwe Mimọ kọ awọn ọdọ lati igba èwe wá, a si kọ wọn lati fi tọwọtọwọ gba ofin Ọlọrun. Ẹda Bibeli ko wọpọ; nitori naa wọn kọ awọn ọrọ iyebiye inu rẹ sori. Ọpọ ninu wọn le ka abala pupọ ninu Majẹmu Laelae ati Tuntun sori. A so awọn ero nipa Ọlọrun pọ mọ awọn iṣẹda ati pẹlu awọn ibukun kekeeke ojoojumọ. Awọn ọmọde kọ lati wo Ọlọrun pẹlu imoore gẹgẹ bi Ẹni ti n funni ni oju rere gbogbo ati itunu gbogbo.

Pẹlu bi awọn obi ti tutu, ti wọn si nifẹ to, wọn fẹran awọn ọmọ wọn pẹlu ọgbọn ju ki wọn jẹ ki itẹra-ẹni-lọrun o mọ wọn lara lọ. Igbe aye idanwo ati inira, boya iku ajẹriku wa niwaju wọn. A kọ wọn lati ọmọde wa lati fi ara da inira, ki wọn tẹriba fun akoso, sibẹ ki wọn ronu, ki wọn si wùwà fun ara wọn. Lati kekere wa, a kọ wọn lati gbe ẹrù iṣẹ, lati sọ ọrọ wọn, ki wọn si ni oye ọgbọn ti o wa ninu idakẹjẹ. Ọrọ aimoye kan ti o ba bọ si eti awọn ọta wọn le ma wu ẹmi ẹni ti o sọ ọ nikan lewu, ṣugbọn ati ti ọpọlọpọ awọn arakunrin rẹ pẹlu; nitori bi ikooko ti n dọdẹ ẹran ije rẹ ni ọta otitọ ṣe n le awọn ti wọn gboya lati sọ wipe wọn ni ominira igbagbọ ẹsin kiri.

Awọn Waldenses padanu ọrọ aye nitori otitọ, pẹlu suuru oniforiti wọn ṣiṣẹ fun ounje wọn. Gbogbo ilẹ ti o ba ṣe e ro laarin awọn oke ni wọn lo daradara; wọn jẹ ki awọn afonifoji ati awọn ilẹ ti ko lọra pupọ o mu eso wọn jade ni kikun pẹlu. Ìsúnlò ati iṣera-ẹni wa lara ẹkọ ti awọn ọmọ wọn gba gẹgẹ bi ohun ajogunba wọn. A kọ wọn wipe Ọlọrun ṣe e ki a gbe igbesi aye wa pẹlu ikora-ẹni-nijanu, ati wipe wọn le pese fun aini ara wọn nipasẹ iṣẹra-ẹni, irotẹlẹ, pẹlẹkutu, ati igbagbọ nikan. Ilana yii nira o si n kaarẹ bani, ṣugbọn o peye, ohun ti eniyan nilo ni ipo iṣubu rẹ, ile ẹkọ ti Ọlọrun ti pese fun itọni ati idagba soke rẹ. Nigba ti o mọ awọn ọdọ lara lati ṣiṣẹ ati lati fi ara da ijiya, wọn ko fi ẹkọ ọpọlọ silẹ. A kọ wọn wipe gbogbo agbara wọn jẹ ti Ọlọrun, ati wipe gbogbo wọn ni wọn ni lati tọju, ki wọn si jẹ ki wọn dagbasoke fun iṣẹ Rẹ.

Awọn ijọ Vaduois fi ara jọ ijọ ni akoko awọn apostoli ninu iwa mimọ ati iṣotitọ wọn. Wọn ko gbagbọ ninu ìjẹgàba popu ati awọn alufa, wọn si gbagbọ ninu Bibeli gẹgẹ bi aṣẹ ti o ga julọ ti ko si le baku. Awọn alufa wọn ko dabi awọn alufa Romu ti n jẹ gàba, ṣugbọn wọn tẹle apẹẹrẹ Oluwa wọn, ti "kò wa ki a le ṣe iranṣẹ fun, ṣugbọn ki o le ṣe iranṣẹ." Wọn bọ agbo Ọlọrun, wọn n dari wọn si papa oko tutu ati si orisun omi iye ti ọrọ mimọ Rẹ. Wọn jinna réré si ami ìwúga ati igberaga eniyan; awọn eniyan naa pejọ pọ, ki i ṣe ninu awọn ile ijọsin titobi ati katidra nla, ṣugbọn labẹ ojiji awọn oke, ninu awọn afonifoji oke Alp, tabi ni akoko ewu, ninu awọn ibi aabo ninu awọn apata, wọn pejọ pọ lati gbọ ọrọ otitọ lati ẹnu awọn iranṣẹ Kristi. Ki i ṣe wipe awọn alufa waasu iyinrere nikan, ṣugbọn wọn bẹ awọn alaisan wo, wọn kọ awọn ọmọde, wọn gba awọn ti n ṣina niyanju, wọn si ṣiṣẹ lati pari aawọ ati lati jẹ ki iṣọkan ati ife o tẹsiwaju. Ọrẹ àtinúwá awọn eniyan ni wọn n ná ni akoko alaafia; ṣugbọn, bi i Pọlu apagamọ, olukuluku wọn ni o kọ iṣẹ tabi okoowo, eyi ti wọn lo lati tọju ara wọn bi wọn ba nilo lati ṣe bẹẹ.

Awọn ọdọ n gba ikọni lati ọdọ awọn alufa. Bi o tilẹ jẹ wipe wọn n kẹkọ ẹka gbogbo ẹkọ, Bibeli ni kókó ohun ti wọn n kọ. Wọn n kọ awọn Iyinrere ti Matiu ati ti Johanu sori, pẹlu ọpọ awọn Episteli. Wọn n kọ Iwe Mimọ silẹ pẹlu. Awọn iwe miran ni gbogbo Bibeli ninu, awọn miran ni abala diẹ, ti awọn ti wọn le ṣe alaye Iwe Mimọ ṣe alaye diẹ sí ninu. Bayi ni wọn ṣe n gbe alumọni otitọ sita ti awọn ti wọn n wa lati gbe ara wọn ga ju Ọlọrun lọ ti n fi pamọ fun igba pipẹ.

Pẹlu suuru, iṣẹ aikaarẹ, nigba miran ninu okunkun ihò ilẹ, wọn a lo imọlẹ fitila, a kọ Iwe Mimọ jade, lẹṣẹẹṣẹ ati ni isọri isọri. Bayi ni iṣẹ naa ṣe n tẹsiwaju, ti ifẹ Ọlọrun ti a fihan n tan jade bi wura pipe; awọn ti wọn ṣe iṣẹ naa nikan ni wọn le mọ bi o ti lagbara, bi o ti mọlẹ, ti o si mọ gaara tó, nitori idanwo ti wọn la koja nitori rẹ. Awọn angeli lati ọrun wa n rọgba yi awọn oṣiṣẹ olootọ wọnyi ka.

Satani lo awọn alufa ati alaṣẹ ijọ paadi lati tẹ ọrọ otitọ rì sinu panti ẹkọ odi, èké, ati igbagbọ asan; ṣugbọn a pa a mọ ni ọna ailabawọn ni gbogbo akoko oju dudu ni ọna ti o yanilẹnu julọ. Ko ni ami aṣẹ eniyan bikoṣe ti Ọlọrun. Awọn eniyan n da ara wọn laamu ninu akitiyan wọn lati ti itumọ Iwe Mimọ ti o han kedere, ti ko si ni wahala rì sinu okunkun, ki wọn ba a le tako ẹri ara wọn. Ṣugbọn bi ọkọ Noah lori igbi omi, ọrọ Ọlọrun la iji ti o fẹ pa a run kọja. Bi iho ilẹ ti kun fun wura ati fadaka ti wọn pamọ si abẹ rẹ, ti gbogbo awọn ti wọn ba fẹ ri ohun iyebiye inu rẹ si nilati gbẹ ilẹ, bẹẹ gẹgẹ ni Iwe Mimọ ṣe ni ohun iṣura otitọ ti o jẹ wipe awọn ti wọn fi tọkantọkan, irẹlẹ ati adura wa nikan ni a fi i han fun. Ọlọrun ṣe Bibeli lati jẹ iwe ẹkọ fun

gbogbo eniyan, fun ọmọde, ọdọ, ati agbalagba, ki a si maa kọ ọ ni gbogbo igba. O fi ọrọ Rẹ fun eniyan gẹgẹ bi ifihan ara Rẹ. Gbogbo otitọ tuntun ti a ba ri jẹ ifihan tuntun nipa iwa Ẹni ti O kọ ọ. Nipa kikọ Iwe Mimọ ni ọna ti Ọlọrun yan lati so awọn eniyan papọ mọ Ẹlẹda wọn ati lati fun wọn ni imọ ti o yè kooro nipa ifẹ Rẹ. O jẹ ọna ibanisọrọ laarin Ọlọrun ati eniyan.

Nigba ti awọn Waldenses ri ibẹru Ọlọrun gẹgẹ bi ipilẹsẹ ọgbọn, oju wọn ko fọ lati mọ bi ibaṣepọ pẹlu araye, imọ nipa eniyan ati igbesi aye iṣẹ ṣiṣe ti ṣe pataki to lati lani lọyẹ ati lati funni ni oye ti o yè kooro. Lati inu ile iwe wọn ninu awọn oke, wọn ran diẹ lara awọn ọdọ wọn lọ si ile ẹkọ giga ni awọn ilu nla ni France tabi Italy, nibi ti ẹka ẹkọ, ìwòye, ati ironu pọ si ju ti ilẹ Alps wọn lọ. Awọn ọdọ ti a ran jade bayi maa n ri idanwo, wọn n ri iwa ibajẹ, wọn n ṣe alabapade awọn aṣoju Satani ti wọn jẹ alarekereke, ti wọn n fi awọn ẹkọ odi ti wọn farasin ati itanjẹ ti o buru julọ kọ wọn. Ṣugbọn ẹkọ wọn lati ọmọde wa jẹ eyi ti o pèsè wọn silẹ fun gbogbo nnkan wọnyi.

Wọn ko gbọdọ ni ẹni ti wọn le fi ọkan tan ninu awọn ile ẹkọ ti wọn n lọ. A ran aṣọ wọn ni ọna ti yoo fi le mu ohun iṣura wọn ti o tobi julọ—awọn ẹda Iwe Mimọ ti wọn ṣe iyebiye—pamọ. Wọn gbe awọn eso wahala ọpọlọpọ oṣu ati ọdun wọnyi dani pẹlu wọn, nibikibi ti wọn ba si ti le ṣe e laiṣe wipe à á fura si wọn, wọn a rọra fi diẹ si oju ọna awọn ti wọn mọ wipe ọkan wọn ṣetan lati gba otitọ. A ti kọ awọn ọdọ Waldenses pẹlu ojuṣe yii lati ori eekun iya wọn wa; wọn ni oye iṣẹ wọn, wọn si ṣe e pẹlu otitọ. Awọn eniyan yipada sinu igbagbọ tootọ ninu awọn ile ẹkọ wọnyi, ikọni wọn si wọ aarin gbogbo ile ẹkọ; sibẹ awọn adari ijọ paadi ko le tọ ẹsẹ ibi ti ohun ti wọn n pe ni ẹkọ odi yii ti n wá, pẹlu gbogbo iwadi finifini wọn.

Ẹmi ajiyinrere ni ẹmi Kristi. Ero akoko ti yoo sọ ninu ọkan ti a sọ di ọtun ni lati mu awọn miran wa si ọdọ Olugbala. Iru ẹmi ti awọn Kristẹni Vadois ni niyi. Wọn mọ wipe Ọlọrun fẹ ki wọn ṣe ju ki wọn pa otitọ mọ ninu iwa mimọ rẹ ninu ijọ wọn lasan lọ; wipe wọn ni ojuṣe nla lati jẹ ki imọlẹ wọn o tan si awọn ti wọn wa ninu okunkun; pẹlu agbara nla to wa ninu ọrọ Ọlọrun wọn wọna lati ja ide ti Romu fi deni. A kọ awọn alufa Vadois lati jẹ onisẹ iranṣẹ, ẹnikẹni ti o ba fẹ wọ inu iṣẹ iranṣẹ nilati kọkọ ni iriri gẹgẹ bi ajiyinrere. Olukuluku wọn nilati ṣiṣẹ ìjèrè ọkan fun ọdun mẹta ni ita ki wọn to wa di ijọ mu ni ile. Iru iṣẹ yii, ti o nilo iṣẹra-ẹni ati ifara-ẹni-rubọ lati ibẹrẹ wa, jẹ itọkasi ti o yẹ fun iṣẹ alufa fun awọn akoko ti n dan ọkan awọn eniyan wo. Awọn ọdọ ti a n gbe ọwọ le lori sinu iṣẹ mimo yii ko ri anfani lati ni ọrọ aye ati ogo niwaju wọn, bikoṣe wahala ati ewu, ati bi o ba ṣe e ṣe, atubọtan ajẹriku. Awọn onisẹ-iyinrere n jade ni mejimeji, bi

Jesu ti ran awọn ọmọ ẹyin Rẹ jade. A saba maa n so ọdọ papọ mọ agbalagba ti o ti ni iriri, ọdọ naa yoo wa labẹ itọsọna ẹnikeji rẹ, ti o ni ojuṣe fun itọsọna rẹ, oun naa si nilo lati gba itọni rẹ. Awọn ajumọ ṣiṣẹ pọ yii ki i saba maa n wa papọ, ṣugbọn loorekoore, wọn maa n pade lati gba adura ati fun igbaniyanju, nipa eyi, wọn n fun ara wọn ni okun ninu igbagbọ.

Kikede afojusun iṣẹ wọn yoo mu ibaku wa; nitori naa, wọn fi ohun ti wọn jẹ gan-an pamọ. Gbogbo awọn alufa ni wọn ni imọ iṣẹ kan tabi okoowo, awọn oniṣẹ-iranṣẹ yii si n ṣe iṣẹ wọn nipa fifi iṣẹ aye boju. Wọn saba maa n ṣiṣẹ okoowo tabi akiri ọja. “Wọn ni aṣọ, ohun ẹsọ ara, ati awọn ohun èlò miran, ti wọn ko le ṣa dede ra ni akoko naa, ayafi ni awọn ọja ti wọn jinna réré; a si n tẹwọ gba wọn gẹgẹ bi olokoowo ni awọn ibi ti à bá ti ta wọn nu gẹgẹ bi oniṣẹ-iyinrere.” Ni gbogbo akoko yii, wọn a gbe ọkan wọn soke si Ọlọrun fun ọgbọn lati funni ni ohun iṣura ti o ju wura tabi okuta iyebiye lọ. Wọn a rọra gbe ẹda Bibeli dani, boya abala diẹ, tabi gbogbo rẹ; nibikibi ti wọn ba sì ti ri aaye, wọn a pe akiyesi awọn onibara wọn si awọn iwe wọnyi. Ni ọpọ igba ifẹ lati ka ọrọ Ọlọrun ma n ti ipa eyi soji, wọn a si fi tayọtayọ fi abala diẹ silẹ pẹlu awọn ti wọn ba fẹ lati gba a.

Iṣẹ awọn oniṣẹ iyinrere wọnyi bẹrẹ ni awọn pẹtẹlẹ ati afonifoji labẹ awọn oke ara wọn, ṣugbọn o tan kalẹ kọja awọn ilẹ wọnyi. Laiwọ bata, ati pẹlu aṣọ ṣágiṣàgi ti o ni abawọn nitori irin ajo, bi i ti Ọga wọn, wọn la awọn ilu nla kọja, wọn si wọ awọn ilẹ jijinna réré lọ. Wọn fọn irugbin iyebiye kaakiri ibi gbogbo. Awọn ijọ n dide ni oju ọna wọn, ẹjẹ awọn ajẹriku si n ṣe ijẹri si otitọ. Ọjọ Ọlọrun yoo fi ikore nla ọkan ti awọn eniyan olootọ yii ṣajọ pẹlu iṣẹ wọn han. Laifi ara han, ati ni idakẹrọrọ, ọrọ Ọlọrun n ri aaye wọ inu ẹsin Kristẹni, ti awọn ilẹ ati ọkan eniyan si n fi ayọ gba a.

Awọn Waldenses ko ri Iwe Mimọ gẹgẹ bi akọsilẹ nipa bi Ọlọrun ti ṣe si awọn eniyan ni atẹyinwa, ati ifihan iṣẹ ati ojuṣe ti isisinyii nikan, ṣugbọn bi ifihan awọn ewu, ati ogo ọjọ iwaju. Wọn gbagbọ wipe opin ohun gbogbo ko jinna mọ, bi wọn si ti n kẹkọ Bibeli pẹlu adura ati omije, awọn ọrọ iyebiye inu rẹ ati ojuṣe wọn lati jẹ ki awọn miran o mọ otitọ inu rẹ ti n gbanila tubọ n tẹ mọ wọn lọkan si. Wọn ri wipe a fi eto igbala han kedere ninu awọn oju ewé mimọ rẹ, wọn si ri itunu, ireti, ati alaafia nipa gbigbagbọ ninu Jesu. Bi imọlẹ ti n wọ inu oye wọn ti o si n mu ọkan wọn yọ, wọn fẹ lati tan itansan rẹ si awọn ti wọn wa ninu okunkun aṣiṣe ijọ paadi.

Wọn ri wipe labẹ itọsọna popu ati alufa, ọpọ awọn eniyan n ṣiṣẹ lasan lati ri idariji nipa jijẹ ara wọn niya fun ẹṣẹ ọkan wọn. A kọ wọn lati wo iṣẹ rere wọn lati gba wọn la, wọn n wo ara wọn ni gbogbo

igba, wọn n ronu lori ipo ẹṣẹ wọn, wọn ri ti ibinu Ọlọrun wa lori wọn, wọn n jẹ ọkan ati ara wọn niya, sibẹ wọn ko ri itusilẹ. Bayi ni ẹkọ Romu ṣe di awọn olufọkansin mọ inu igbekun. Ọpọlọpọ ni wọn fi ọrẹ ati ibatan wọn silẹ, ti wọn si n gbe igbesi aye wọn ninu ile tubu awọn ajẹjẹ ẹsin. Pẹlu awẹ atigbadegba ati ifiyajẹni nla, pẹlu iṣọ oru, nipa sisun sori ilẹ tutu ilé wọn ti o ṣokunkun ti o n rin fun omi fun ọpọlọpọ wakati, pẹlu irinajo gigun gbọọrọ, pẹlu ironupiwada ti o fini ṣẹsin ati ijẹniniya ti o dẹru bani, ọpọlọpọ n ṣiṣẹ lasan lati ri alaafia ọkan. Imọlara ẹṣẹ n fi iya jẹ wọn, ẹru ibinu igbẹsan Ọlọrun n lé wọn kiri, ọpọlọpọ n jiya lọ bayii, titi ti wọn yoo fi gbẹmi mi, laisi itansan imọlẹ tabi ireti kan, wọn ri sinu iboji.

Awọn Waldenses n fẹ lati bu akara iye fun awọn ọkan ti ebi n pa wọnyi, lati ṣi iṣẹ iranṣẹ alaafia ninu awọn ileri Ọlọrun fun wọn, ati lati tọka wọn si Kristi gẹgẹ bi ireti wọn kan ṣoṣo fun igbala. Wọn gbagbọ wipe ikọni ti o sọ wipe iṣẹ rere le ṣe iwẹnumọ fun riru ofin Ọlọrun duro lori èké. Gbigbẹkẹle iṣẹ eniyan tako igbagbọ ninu ifẹ Kristi ti ko lopin. Jesu ku gẹgẹ bi irubọ fun eniyan nitori eniyan ẹlẹṣẹ ko le ṣe ohun kan lati le ri itẹwọgba lọdọ Ọlọrun. Iṣẹ Olugbala ti a kan mọ agbelebu ti O si jinde ni ipilẹ igbagbọ Kristẹni. Ọkàn nilati gbẹkẹle Kristi ni ọna ti o jẹ ojulowo, ki o si wa ni iṣọkan pẹlu Rẹ, bi apá ti jẹ si ara, tabi ẹka si ajara.

Awọn ikọni popu ati awọn alufa jẹ ki awọn eniyan o ri iwa Ọlọrun, ani ti Kristi paapa, bi ti onroro, onirobinujẹ, ati oluṣẹrubani. A fi Olugbala han gẹgẹ bi ẹni ti ko ni ibanikẹdun pẹlu eniyan ninu ipo isubu rẹ debi pe a nilati wa ibalaja awọn alufa ati awọn eniyan mimọ. Awọn ti ọrọ Ọlọrun ti la lọyẹ n fẹ lati tọka awọn ọkan wọnyi si Jesu gẹgẹ bi Olugbala ti O nifẹ ti O si n kaanu fun wọn, ti O n duro pẹlu ọwọ Rẹ ti o ṣi silẹ, ti O n pe gbogbo eniyan wa pẹlu ẹru ẹṣẹ, aniyan, ati ikaarẹ wọn wa si ọdọ Oun. Wọn fẹ lati ko awọn idena ti Satani to jọ kuro eyi ti o di awọn eniyan lọwọ lati maṣe jẹ ki wọn o ri awọn ileri wọnyi, ki wọn si wa si ọdọ Ọlọrun taara, ni jijẹwọ ẹṣẹ wọn, ki wọn si gba idariji ati alaafia.

Tọkantọkan ni awọn onisẹ-iyinrere awọn ara Vadois fi ṣe alaye awọn otitọ iyebiye iyinrere si ẹnikẹni ti o ba fẹ lati mọ. A rọra mu awọn abala Iwe Mimọ ti a fi pẹlẹkutu kọ sita. Ohun ti o funni ni ayọ julọ ni lati fun ọkan olootọ ti ẹṣẹ ti di ẹru wuwo le lori, ẹni ti ko ri ohun miran ju igbẹsan Ọlọrun ti n duro lati ṣe idajọ, ni ireti. Pẹlu ete ti o n gbọn pẹpẹ ati oju ti o kun fun omije, ni ọpọ igba lori eekun rẹ, a ṣi awọn ileri iyebiye ti o fi ireti kan ṣoṣo ti ẹlẹṣẹ ni han arakunrin rẹ. Bayi ni imọlẹ otitọ ṣe n wọ inu ọpọ ọkan ti wọn ṣokunkun, ti o n gbá ikuuku dudu seyin, titi ti Oorun Ododo fi tan sinu ọkan pẹlu iwosan

ninu itansan Rẹ. Ni ọpọ igba a maa n ka awọn abala Iwe Mimọ kan ni àkàtúnkà, ti olugbọ naa a fẹ ki a tun ka lẹẹkan si, afi bi ẹnipe o fẹ fi da ara rẹ loju bi oun ba gbọ daradara. A n fẹ ki a tun awọn ọrọ wọnyi ka ni pataki julọ: "Ẹjẹ Jesu Kristi Ọmọ Rẹ fọ wa mọ kuro ninu ẹṣẹ gbogbo." 1 Johanu 1:7. "Bi Mose ti gbe ejo soke ni aginju, bẹẹ gẹgẹ ni a nilati gbe Ọmọ eniyan soke: pe ẹnikẹni ti o ba gba A gbọ ki yoo ṣegbe, ṣugbọn yoo ni iye ainipẹkun." Johanu 3:14, 15.

Ọpọlọpọ ni wọn ri otitọ nipa ohun ti Romu n sọ. Wọn ri bi ìbálàjà eniyan tabi ti angẹli nitori ẹlẹṣẹ ti jẹ asan to. Bi imọlẹ tootọ ti wọ inu ọkan wọn, wọn kigbe pẹlu ayọ wipe: "Kristi ni alufa mi; ẹjẹ Rẹ ni irubọ mi; pẹpẹ Rẹ ni ibi ijẹwọ ẹṣẹ mi." Wọn gbe ara wọn si ori iṣẹ Jesu patapata, wọn si n sọ awọn ọrọ wọnyi ni atunsọ, "Laisi igbagbọ, ko ṣe e ṣe lati wu U." Heberu 11:6. "Ko si orukọ miran labẹ ọrun ti a fifun eniyan, nipasẹ eyi ti a fi le gba wa la." Iṣe 4:12.

Idaniloju ifẹ Olugbala dabi eyi ti o pọju fun diẹ lara awọn ọkan otoṣi ti igbi n bi kiri yii lati gbagbọ. Alaafia nla ni o mu wa si ọkan wọn, itansan imọlẹ ti o tan si wọn pọ to bẹẹ gẹẹ ti o fi dabi ẹnipe a gba wọn si ọrun. Wọn fi ifọkantan gbe ọwọ wọn le ọwọ Kristi; wọn gbe ẹṣẹ wọn le ori Apata Ayeraye. Gbogbo ibẹru iku salọ. Wọn wa n fẹ lati ni ọgba ẹwọn, ati idana-sunni bi eyi yoo ba fi ọla fun orukọ Olurapada wọn.

Bayi ni a ṣe n mu ọrọ Ọlọrun jade ti a si n ka a ni ibi ti o farasin, nigba miran, si ẹnikan ṣoṣo, nigba miran si ẹgbẹ kekere ti wọn fẹ imọlẹ ati otitọ. Ni ọpọ igba a maa n lo gbogbo oru bayi. Iyalẹnu ati ijọloju awọn olugbọ maa n pọ to bẹẹ gẹẹ ti wọn saba maa n da onisẹ iranṣẹ aanu duro ninu iwe kika rẹ titi ti oye wọn a fi le mọ itumọ iroyin ayọ igbala. Ni ọpọ igba wọn saba maa n sọ wipe: "Ṣe Ọlọrun yoo gba ọrẹ mi lootọ? Ṣe yoo rẹrin si mi? Ṣe yoo dari ẹṣẹ mi jin mi? A a ka idahun naa si wọn wipe: "Ẹ wa si ọdọ Mi gbogbo ẹyin ti n ṣisẹ ti a si di ẹru wuwo le lori, Emi yoo si fi isinmi fun yin." Matiu 11:28.

Igbagbọ di ileri naa mu, a si gbọ esi ayọ wipe: "N ko nilo lati ṣe irin ajo ẹsin gigun mọ; ko si irin ajo inira lọ si awọn ojubọ mimọ mọ. Mo le wa si ọdọ Jesu bi mo ti ri, ni ẹlẹṣẹ ati alaimọ, ko si ni ta adura fun ironupiwada danu. 'Ati dari ẹṣẹ rẹ ji ọ.' Temi, ani ti temi, a le dari rẹ ji!"

Igbi ayọ mimọ kun inu ọkan wọn, wọn si gbe orukọ Jesu ga pẹlu ọpẹ ati iyin. Awọn ọkan alayọ wọnyi pada lọ si ile wọn lati tan imọlẹ naa ka, lati tun iriri wọn sọ fun awọn miran ni ọna ti wọn fi le sọ ọ daradara; wipe wọn ti ri Ọna tootọ ati iye. Agbara ti o lọwọ, ti o si ṣe ajeji wa ninu ọrọ Iwe Mimọ ti o n sọ ọrọ taara si ọkan awọn ti wọn n fẹ otitọ. Ohun Ọlọrun ni, o si n fun awọn ti wọn ba gbọ ni idaniloju.

Ojiṣẹ otitọ ba ọna rẹ lọ; ṣugbọn irisi irẹlẹ, iṣotitọ, itara ati ifọkansin rẹ saba maa n jẹ koko fun ijiroro. Ni ọpọ igba, awọn olugbọ rẹ ki i beere ibi ti o ti wa tabi ibi ti o n lọ ni ọwọ rẹ. Wọn kọkọ kun fun iyalẹnu, lẹyin eyi wọn kun fun ọpẹ ati ayọ, ti o fi jẹ wipe wọn ko ronu lati bi i leere. Nigba ti wọn ba rọ ọ lati tẹle wọn lọ si ile wọn, a fesi wipe oun nilati bẹ awọn aguntan ti wọn ṣọnu ninu agbo wo. Wọn a sọ wipe: Abi o le jẹ angẹli lati ọrun wa?

Ni ọpọ igba a kò ni ri ojiṣẹ otitọ mọ. Boya o ti lọ si ilẹ miran, tabi o n ku lọ ninu tubu ti a ko mọ, tabi egungun rẹ ti n funfun nibi ti o ti jẹri si otitọ. Ṣugbọn a ko le pa ọrọ ti o ti sọ silẹ run. Wọn n ṣiṣẹ wọn ninu ọkan awọn eniyan; a o mọ ayọrisi alabukun wọn ni idajọ.

Awọn oniṣẹ iyinrere ara Waldenses n ko ogun ja ijọba Satani, agbara okunkun si wa ni ifura ti o ga si. Gbogbo akitiyan lati jẹ ki otitọ o tẹsiwaju ni ọmọ alade iwa ibi n wo ti o si n ru ibẹru awọn aṣoju rẹ soke. Awọn adari ijọ padi ri ewu ti o lagbara si iṣẹ wọn ninu iṣẹ awọn alarinkiri otoṣi wọnyi. Bi a ba jẹ ki imọlẹ otitọ o tan laisi idiwọ, yoo gbá ikuuku aṣiṣe nla ti o bo awọn eniyan mọlẹ kuro. Yoo dari ọkan awọn eniyan si Ọlọrun nikan ṣoṣo, yoo si ba agbara Romu jẹ.

Iwalaaye awọn eniyan ti wọn di igbagbọ ijọ atijọ mu yii jẹ ẹri atigbadegba si iyapa Romu, nitori naa, o ru inunibini ati ikorira kikoro soke. Bi wọn ti kọ lati kọ Iwe Mimọ silẹ jẹ iwa ẹṣẹ ti Romu ko le fi ara mọ. O pinnu lati pa wọn rẹ kuro lori ilẹ aye. Bayi ni a ṣe ko ogun ẹsin kikan bá awọn eniyan Ọlọrun ninu ilẹ wọn laarin awọn oke. Awọn oluwadi igbagbọ n le wọn kiri, iṣẹlẹ bi Abeli alaiṣẹ ti ṣubu niwaju Keeni apaniyan tun ṣẹlẹ laimoye igba.

Latigbadegba, a n sọ ilẹ ọlọra wọn di ahoro, a wo ibugbe ati ile ijọsin wọn lulẹ, ti o fi jẹ wipe nibi ti papa oko tutu ati ile awọn alaiṣẹ, awọn eniyan ti n mura siṣẹ fi igba kan wa ri, wa di kiki da aṣalẹ. Bi inu ẹranko buburu ti n ru soke si nigba ti o ba tọ ẹjẹ wo, bẹẹ ni ijiya awọn wọnyi ṣe n ru ibinu awọn ọmọ ijọ padi soke. A le ọpọlọpọ awọn ẹlẹri fun igbagbọ mimọ yii wọ inu awọn oke, a si dọdẹ wọn ninu afonifoji ti wọn sapamọ si, nibi ti igbo nla ati gegele okuta fi wọn pamọ si.

Ko si ohun kan ti a le ri wi si nipa iwa awọn ti a fi ofin dè wọnyi. Ani awọn ọta wọn funra wọn sọ wipe wọn jẹ alalaafia, eniyan jẹjẹ ti o jẹ olufọkansin. Ẹṣẹ nla ti wọn ṣẹ ni wipe wọn ko sin Ọlọrun gẹgẹ bi ifẹ popu. Gbogbo ifisẹsin, ibaku ati ifiyajẹni ti awọn eniyan tabi ẹmi eṣu le gbero ni a ṣe si wọn nitori iwa eṣe yii.

Ni igba kan ti Romu pinu lati pa ẹgbẹ ti a korira yii run, popu pa aṣẹ kan ti o da wọn lẹbi gẹgẹ bi ẹlẹkọ odi, o si fi aye silẹ ki a pa wọn. A ko fi ẹsun kan wọn gẹgẹ bi ọlẹ, tabi alaiṣootọ, tabi mọdaru; ṣugbọn a sọ wipe wọn ni irisi ifọkansin ati iwa mimọ ti o n tan "awọn

aguntan agbo tootọ jẹ.” Nitori naa popu pa aṣẹ “ki a pa awọn ẹgbẹ ẹlẹgbin, elero buburu ati onirira wọnyi bi ejò olóró bi wọn ba kọ lati yipada.” Njẹ ọba agberaga yii ronu lati ṣe alabapade awọn ọrọ rẹ wọnyi lẹẹkansi? Njẹ o mọ wipe a kọ wọn silẹ ninu awọn iwe ọrun, lati le doju kọ oun ni idajọ? “Niwọn igba ti ẹyin ti ṣe e si eyi ti o kere julọ ninu awọn arakunrin Mi wọnyi,” Jesu wipe, “ẹyin ti ṣe e si Mi.” Matiu 25:40.

Aṣẹ naa pe gbogbo awọn ọmọ ijọ lati da ara pọ lati ja ogun ẹsin ni atako si awọn ẹlẹkọ odi. Lati le fun wọn ni imoriya fun iṣẹ laabi yii, o “fun wọn ni ominira kuro ninu irora ati ijiya ẹsin, ni ti gbogboogbo ati ni pato; o tú gbogbo awọn ti wọn ba da ara pọ mọ ija ẹsin yii kuro ninu gbogbo ẹjẹ ti wọn ba ti jẹ; o fun wọn ni aṣe lati ni ohunkohun ti wọn ba gba ni ọna aitọ; o si ṣe ileri idariji ẹṣẹ fun gbogbo ẹṣẹ awọn ti wọn ba pa ẹlẹkọ odi. O fagile gbogbo adehun ti a ba ṣe ti awọn Vadois ba le ri èrè nibẹ, o paṣẹ ki gbogbo awọn alabagbe wọn o fi wọn silẹ, o ki gbogbo eniyan nilọ lati maṣe fun wọn ni iranlọwọ kankan, o si fun gbogbo eniyan ni anfani lati ko gbogbo dukia wọn.” Akọsilẹ yii fi iru ẹmi ti o n ṣiṣẹ labẹlẹ han. Ki i ṣe ohùn Kristi bikoṣe igbe dragoni naa ni a n gbọ ninu rẹ.

Awọn adari ijọ paadi ko le jẹ ki iwa wọn o dọgba pẹlu odiwọn nla ofin Ọlọrun, ṣugbọn wọn gbe odiwọn ti o ba ara wọn mu kalẹ, wọn si pinu lati fi ipa mu gbogbo eniyan lati pa a mọ nitori pe Romu fẹ bẹẹ. A ṣe awọn ofin ti wọn buru julọ. Awọn alufa ati popu oniwa-ibajẹ ati asọrọ-odi n ṣe iṣẹ ti Satani yan fun wọn lati ṣe. Aanu ko ri aaye ninu aye wọn. Iru ẹmi kan naa ti o kan Kristi mọ agbelebu ti o tun pa awọn apostoli, iru ẹmi kan naa ti o mi si Nero mujẹmujẹ lati tako awọn olootọ ni akoko rẹ, ni o n ṣiṣẹ lati pa awọn ti Ọlọrun fẹran run kuro ninu aye. Awọn ti wọn bẹru Ọlọrun fi ara da inunibini ti a ṣe si wọn fun ọpọlọpọ ọdun pẹlu suuru ati iduroṣinṣin ti o bu ọla fun Olurapada wọn. Pẹlu gbogbo ogun ẹsin ti a ko ja wọn, ati ipakupa ti a pa wọn, wọn tẹsiwaju lati rán awọn onisẹ-iyinrere wọn jade lati tan otitọ iyebiye kalẹ. A dọdẹ wọn de oju iku; sibẹ, ẹjẹ wọn bu omi rin irugbin ti a gbin, ko si baku lati so eso. Bayi ni awọn Waldenses ṣe ṣe ijẹri fun Ọlọrun ni ọpọ ọdun ṣaaju ki a to bi Luther. Wọn gbin irugbin iṣẹ Atunṣe ti o bẹrẹ ni akoko Wycliffe kaakiri ilẹ gbogbo, ti o tobi ti o si fi ẹsẹ rinlẹ ni akoko Luther, ti yoo si tẹsiwaju titi de opin akoko nipasẹ awọn ti wọn ba ṣetan lati jiya ohun gbogbo nitori “ọrọ Ọlọrun, ati fun ẹri Jesu Kristi.” Ifihan 1:9.

5

John Wycliffe

Ṣaaju akoko Atunṣe awọn akoko kan wa ti o jẹ wipe awọn ẹda Bibeli perete ni wọn wa, ṣugbọn Ọlọrun ko jẹ ki a pa ọrọ Oun run patapata. Awọn otitọ rẹ ko le fi ara sin titi lae. O rọrun fun lati tu ọrọ iye silẹ bi o ti ṣe rọrun fun lati ṣi ilẹkun tubu silẹ, ki O ṣi awọn ilẹkun irin silẹ lati tu awọn iranṣẹ Rẹ silẹ. Ni awọn orişirişi orilẹ-ede ni Europe, Ẹmi Ọlọrun n mi si awọn eniyan lati wa otitọ bi ohun işura ti a ko pamọ. Agbara Ọlọrun dari wọn sinu Iwe Mimọ, wọn kọ awọn abala mimọ rẹ pẹlu ifẹ ọkan gbigbona. Wọn ṣetan lati gba imọlẹ laika ohun ti yoo ná wọn si. Bi o tilẹ jẹ wipe wọn ko le ri ohun gbogbo kedere, wọn ri ọpọ awọn otitọ ti a ti rì mọlẹ fun igba pipẹ. Bi ojişẹ ti a ran lati Ọrun, wọn jade lọ, wọn n ja ide aşişe ati igbagbọ asan, wọn si n pe awọn ti a ti di ni igbekun fun igba pipẹ lati dide lati gba ominira wọn.

Ayafi laarin awọn Waldenses, ede ti awọn ọmọwe ni oye rẹ nikan ni a fi kọ ọrọ Ọlọrun; ṣugbọn akoko ti to lati tumọ Iwe Mimọ ki a si fifun awọn eniyan ni ilẹ gbogbo ni ede abinibi wọn. Ọganjọ oru aye ti kọja. Akoko okunkun n kọja lọ, a si n ri ami ọjọ ti n yọ ni ibi pupọ.

"Irawọ owurọ işẹ Atunṣe" yọ ni England ni ọrundun kẹrinla. John Wycliffe jẹ akede atunṣe, ki i ṣe fun England nikan, bikoṣe fun gbogbo ilẹ ti n ṣe ẹsin Kristẹni. A ko le pa ọrọ àtakò nla ti a gba a laaye lati sọ si Romu lẹnu mọ laelae. Atako naa ni o bẹrẹ ijijadu ti o yọri si idasilẹ ẹnikọọkan, awọn ijọ, ati awọn orilẹ ede.

Wycliffe gba ẹkọ aye, ibẹru Ọlọrun si ni o jẹ ipilẹşẹ ọgbọn fun. A da mọ ni ile ẹkọ giga fun ifọkansin, awọn ẹbun titayọ, ati ijafafa ninu iwe rẹ. Ninu ongbẹ rẹ fun imọ o fẹ lati ni oye nipa gbogbo ẹka ẹkọ. O

kẹkọ nipa imọ ẹkọ ironujinlẹ, nipa awọn ofin ijọ, ati awọn ofin iṣelu, paapa julọ ti orilẹ ede rẹ. Ninu awọn iṣẹ rẹ ni ọjọ iwaju itumọ ẹkọ ti o kọ lati ilẹ wa fi ara han. Imọ kikun nipa iṣọwọronujinlẹ ti akoko rẹ ran an lọwọ lati fi awọn aṣiṣe rẹ han; nipasẹ ẹkọ rẹ nipa ofin ilu ati ti ijọ, o ṣetan lati ṣiṣẹ ninu ijakadi nla fun ominira iṣelu ati ẹsin. Nigba ti o lè lo ohun ija ti a mu jade lati inu ọrọ Ọlọrun, o ni oye ẹkọ ile iwe, o si ni oye nipa ète awọn ọmọwe. Agbara ijafafa rẹ ati okun imọ rẹ jẹ ki awọn ọta ati ọrẹ rẹ o bọwọ fun. Awọn atẹle rẹ ri pẹlu itẹlọrun wipe ọga wọn tayọ laarin awọn ọlọpọlọ pipe orilẹ ede naa; awọn ọta rẹ ko sile kẹgan iṣẹ atunṣe rẹ nipa fifi aimọkan ati ibaku oniwaasu rẹ han.

Nigba ti Wycliffe si wa ni ile ẹkọ giga, o bẹrẹ si ni i kọ ẹkọ Iwe Mimọ. Ni awọn akoko naa ti o jẹ wipe ede atijọ nikan ni a fi kọ Bibeli, awọn ọmọwe ni anfani lati de idi orisun otitọ, ṣugbọn awọn ti ko mọwe ko ni iru anfani yii. Nipa eyi ná, a ti pese ọna silẹ fun Wycliffe lati ṣe iṣẹ rẹ ni ọjọ iwaju gẹgẹ bi Alatunṣe. Awọn ọmọwe ti kẹkọ ọrọ Ọlọrun wọn si ti ri otitọ nla nipa oore ọfẹ Rẹ ti a fihan nibẹ. Ninu awọn ikọni wọn, wọn tan imọ nipa otitọ yii kálẹ, wọn si jẹ ki awọn miran o yipada si ọrọ iye.

Nigba ti Wycliffe dari iyè rẹ si Iwe Mimọ, o kọ ẹkọ rẹ pẹlu iru awofin ti o ran-an lọwọ lati ni oye ẹkọ rẹ ni ile ẹkọ. Ki o to di akoko yii, o ni imọlara àìní ti ẹkọ iwe tabi ikọni ijọ kò lè tẹ lọrun. O ri ohun ti o n ṣe òpò lasan lati ni ninu ọrọ Ọlọrun. Nibi ó ri ifihan ètò igbala, a si fi Kristi han gẹgẹ bi alagbawi kan ṣoṣo fun eniyan. O fi ara rẹ jin fun iṣẹ Kristi o si pinnu lati kede awọn otitọ ti o ri.

Bii ti awọn alatunṣe ti o tẹle, Wycliffe ko mọ ibi ti iṣe oun yoo gbé oun lọ nigba ti o n bẹrẹ rẹ. Ko mọọmọ duro lati tako Romu. Ṣugbọn ifọkansin si otitọ ko le ṣe ki o ma mu wọya ija pẹlu irọ. Bi o ti n ri awọn aṣiṣe ijọ padi daradara si, bẹẹ ni o n fi ifọkansin waasu ikọni Bibeli si. O ri wipe Romu ti kọ ọrọ Ọlọrun silẹ lati gba ikọni eniyan; laibẹru, o fi ẹsun kan awọn alufa wipe wọn ti kọ Iwe Mimọ silẹ, o sọ wipe ki a fun awọn eniyan ni Bibeli ki a si da pada si ipo alaṣẹ ninu ijọ. O jẹ olukọ ti o da ṣaka ati oniwaasu ti ẹnu rẹ yọ, igbesi aye rẹ si jẹ ifihan awọn otitọ ti o n waasu. Imọ rẹ ninu Iwe Mimọ, agbara iṣọwọronu rẹ, igbe aye iwa mimọ rẹ, ati igboya ati iṣotitọ rẹ ti ko le yẹ jẹ ki gbogbo eniyan o bọwọ fun, wọn si ni igbẹkẹle ninu rẹ. Ọpọlọpọ awọn eniyan ni igbagbọ wọn tẹlẹ ko tẹ lọrun mọ bi wọn ti n ri iwa ẹṣẹ ti o n gbilẹ ninu Ijọ Romu, wọn si gba awọn otitọ ti Wycliffe n waasu rẹ pẹlu ayọ ti wọn ko le pa mọra; ṣugbọn inu bi awọn olori ijọ paadi nigba ti wọn ri wipe Alatunṣe yii n lokiki ju wọn lọ.

Wycliffe jẹ ẹni ti o saba maa n da irọ mọ, o si fi aibẹru tako ọpọ awọn aṣiṣe ti aṣẹ Romu fi ọwọ si. Nigba ti o n ṣiṣẹ gẹgẹ bi oniwaasu

fun ọba, o fi igboya tako sisan owo orí ti ọba England n san fun popu o si fi han wipe bi popu ti n lo aṣẹ lori awọn ọba tako ironu eniyan ati ifihan. Awọn ohun ti popu beere fun fa ibinu nla, awọn ikọni Wycliffe si ni ipa lori awọn adari orilẹ ede naa. Ọba ati awọn ijoye rẹ fi ohun ṣọkan lati tako bi popu ṣe n lo aṣẹ ọba, ati lati san owo ori. Bayi ni a ṣe ṣe ikọlu nla si aṣẹ popu ni England.

Iwa buburu miran ti Alatunṣe naa gbe ogun aidẹyin tì ni ẹgbẹ awọn alufa oníbárà. Awọn ọmọ ẹgbẹ yii pọ bi eṣú ni England, wọn si n ko àbàwọn bá titobi ati ọrọ aje ilẹ naa. Ibaku n de ba iṣẹ ọwọ, èto ẹkọ ati ilana iwùwàsí. Ki i ṣe wipe igbe aye ọlẹ ati oníbárà awọn ajẹjẹ ẹsin yii n gbá ọrọ awọn eniyan lọ nìkan, ṣugbọn o n jẹ ki a gan iṣẹ ṣiṣe. O sọ awọn ọdọ di alailagbara ati oniwa-ibajẹ. Ọpọlọpọ awọn eniyan ni wọn ti ipasẹ awọn ẹgbẹ ẹsin yii wọ inu ile ẹsin ti wọn si fi ara wọn jin fun igbesi aye àdánìkàngbé, wọn n ṣe eyi laiṣe wipe awọn obi wọn fi ọwọ si, ati ni igba miran, laiję ki wọn mọ, tabi ni àtakò si aṣẹ wọn. Ọkan lara awọn Baba Ijọ akọkọ sọ wipe igbesi aye adanikangbe ga ju ifẹ ati ojuṣe ẹni fun ara ile ẹni lọ; o sọ wipe: "Bi baba rẹ ba dubulẹ si ẹnu ilẹkun ti o n sọkun ti o si n kigbe, ti iya rẹ si yọ ara ti o fi bi ọ silẹ ati ọyan ti o fi tọ ọ, ri i wipe o tẹ wọn mọlẹ, ki o si lọ taara si ọdọ Kristi. Nipasẹ "iwa ika alailaanu" yii, bi Luther ti ṣe pe e, "ti o jọ ti kọlọkọlọ ati ti onroro, ju ti Kristẹni ati ti eniyan lọ" ni a n gba fi sé ọkan awọn ọmọ le si awọn obi wọn. Bi awọn adari ijọ paadi, bii awọn Farisi ti igbaani, ṣe n sọ ofin Ọlọrun di asan nipasẹ ofin wọn niyi. Bayi ni a ṣe n sọ ilé di ahoro ti awọn obi kò si ni ri ibakẹgbẹ awọn ọmọ wọn lọkunrin ati lobinrin mọ.

Afihan èké awọn alufa onibara yii tan awọn ọmọ ile ẹkọ giga paapa jẹ ti wọn si da ara pọ mọ awọn ẹgbẹ wọn. Ọpọlọpọ ni wọn yipada kuro ninu igbesẹ yii, nigba ti wọn ri wipe wọn ti kó abawọn ba igbesi aye ara wọn, ti wọn si ti ko ibanujẹ ba awọn obi wọn. Ṣugbọn nigba ti wọn ba ti wọ inu ẹwọn wọn, ko le ṣe e ṣe fun wọn lati gba ominira wọn. Ọpọ obi, nitori ibẹru awọn alufa onibara, kọ lati ran awọn ọmọ wọn lọ si ile ẹkọ giga. Iye awọn akẹkọ ti wọn wa ninu awọn ile ẹkọ giga dinku gan-an ni. Awọn ile ẹkọ n jiya, aimọkan si wọpọ.

Popu ti fun awọn alufa wọnyi ni aṣẹ lati gbọ ijẹwọ ẹṣẹ ati lati dari ẹṣẹ jini. Eyi si jẹ orisun iwa buburu nla. Wọn pinnu lati jẹ ki èrè wọn o pọ si, awọn alufa wọnyi ṣetan lati funni ni idariji ẹṣẹ debi pe gbogbo ọdaran ni ibi gbogbo ni wọn n lọ si ọdọ wọn, nitori idi eyi, iwa ọdaran ti o buru jai gbilẹ si. A fi awọn alaisan ati awọn alaini silẹ lati jiya, awọn ẹbun ti a ba lo lati ran aini wọn lọwọ lọ si ọdọ awọn alufa ti wọn maa n hale mọ awọn eniyan lati le gba ẹbun lọwọ wọn, ti wọn si n bu ẹnu atẹ lu ainifọkansin awọn ti ko ba fun ẹgbẹ wọn ni ẹbun.

Pẹlu bi wọn ti n sọ wipe wọn jẹ otoṣi, ọrọ awọn alufa yii tubọ n pọ si nigba gbogbo ni; awọn ile nla wọn ati tabili onjẹ aladidun wọn ṣe afihan aini orilẹ ede naa ti n pọ si. Nigba ti wọn n lo akoko wọn ninu igbadun ati faaji, wọn a ran awọn eniyan alaimọkan jade, ti wọn ko mọ ju lati pa alọ, lati sọ itan ti o yanilẹnu, ati lati ṣe ẹfẹ ti yoo pa awọn eniyan lẹrin lọ, ti wọn yoo si jẹ ki wọn tubọ jẹ òpè si ọgbọn ẹwẹ awọn alufa wọnyi si. Sibẹ awọn alufa wọnyi tubọ n ni agbara lori awọn ọpọ eniyan alaimọkan si ni, wọn n jẹ ki wọn gbagbọ wipe gbogbo ohun ti a nilo ninu iṣẹ isin ko ju ki a gba aṣẹ popu, ki a jọsin awọn eniyan mimọ ti wọn ti ku, ki a si fun awọn alufa ni ẹbun lọ, eyi to lati fun wọn ni aaye ni ọrun.

Awọn ọmọwe ati olufọkansin ti ṣiṣẹ laini ayọrisi lati ṣe atunṣe ninu awọn ẹgbẹ ajẹjẹ ẹsin wọnyi; ṣugbọn Wycliffe, pẹlu oye ti o yè kooro kọlu gbongbo iwa ibi naa, o sọ wipe ilana naa funra rẹ jẹ iro ati wipe wọn nilati pa a rẹ. Ijiroro ati iwadi ba bẹrẹ. Bi awọn alufaa yii ti n la orilẹ ede naa kọja, ti wọn n ta idariji popu, ọpọlọpọ wa n ṣe iyemeji boya o ṣe e ṣe lati ra idariji ẹṣẹ pẹlu owo, wọn wa n beere boya o yẹ ki wọn wa idariji lati ọdọ Ọlọrun dipo lati ọdọ alufa Romu. Ọpọlọpọ ni ẹnu yà nitori ilọnilọwọgba awọn alufaa yii, awọn ti o dabi ẹnipe iwa wọbia wọn ko ṣe e tẹ lọrun. Wọn sọ wipe: “Awọn ajẹjẹ ẹsin ati alufa Romu n jẹ wa bi aisan jẹjẹrẹ. Ọlọrun nilati gba wa, tabi ki awọn eniyan o ṣegbe.” Lati le fi iwa ojukokoro wọn yii pamọ, awọn ajẹjẹ ẹsin oníbárà yii n sọ wipe wẹn n tẹle apẹẹrẹ Olugbala ni, wọn n sọ wipe oju rere awọn eniyan ni o gbe Jesu ati awọn ọmọ ẹyin Rẹ ró. Oro yii ni o ko ijamba ba iṣe wọn, nitori ti o dari ọpọlọpọ awọn eniyan sinu Bibeli lati kọ nipa otitọ funra wọn— ayọrisi eyi ti Romu ko fẹ rara. Ọkan awọn eniyan yi si Orisun otitọ, eyi ti i ṣe erongba rẹ lati fi pamọ.

Wycliffe bẹrẹ si ni i kọ iwe pelebe o si n tẹ ẹ jade lati fi tako awọn alufa oníbárà naa, ki i ṣe lati ba wọn wọ inu ariyanjiyan, bikoṣe lati dari ọkan awọn eniyan si awọn ẹkọ inu Bibeli ati si Ẹni ti O kọ ọ. O sọ wipe agbara lati darijini tabi agbara lati léni kuro ninu ijọ wa lọwọ popu ni iwọn kan naa ti o fi wa lọwọ awọn alufa lasan, ati pe ko si ẹni ti a lè lé kuro ninu ijọ ayafi bi o ba ti kọkọ fa idajọ Ọlọrun wa si ori ara rẹ. Ko si ọna ti o dara ju eyi lọ lati bi ajaga ẹmi ati ti ara eyi ti popu gbe kalẹ ti a si fi di ọpọlọpọ ni igbekun ni emi ati ni ara wó.

A pe Wycliffe lati wa wi awijare nipa ẹtọ ọba England lati tako ijẹgaba Romu; nitori pe o je aṣoju ọba, o lo ọdun meji ni Netherlands ninu apero pẹlu awọn aṣoju popu. Nibi o ni ijiroro pẹlu awọn oloye ijọ lati France, Italy, ati Spain, o tun ni anfani lati ri ohun ti o n ṣẹlẹ ni ikọkọ, o si ni oye nipa ọpọlọpọ awọn nnkan ti i ba ṣokunkun si ni

England. O kọ nipa awọn ohun ti yoo fun iṣẹ rẹ lokun ni ọjọ iwaju. O kọ nipa afojusun ati bi awọn ilana ijọ ti ri gan-an ninu awọn aṣoju ti wọn wa lati aafin popu wọnyi. O pada si England lati tẹnumọ awọn ikọni rẹ tẹlẹ pẹlu itara ti o pọ si, o n sọ wipe, ojukokoro, igberaga ati ẹtan ni awọn ọlọrun Romu.

Ninu ọkan ninu awọn iwe pelebe rẹ, o sọ nipa popu ati awọn ti n ba gba owo ni ọna yii: "Wọn n ko onjẹ oojọ awọn alaini ati ẹgbẹẹgbẹrun lati inu owo ọba kuro ni ilẹ wa lọdọọdun fun ami majẹmu ati awọn ohun ẹmi, ti ẹkọ odi ríra ohun ẹmi ti a fi gegun, ti o si n jẹ ki gbogbo awọn Kristẹni o fi ọwọ si ẹkọ odi yii ti wọn si i n gbe larugẹ. Ti o fi jẹ pe bi o tilẹ jẹ wipe agbegbe wa ni òkè nla ti o kun fun wura, ẹnikẹni ko gbọdọ fi ọwọ kan-an ayafi awọn alufa alafẹ aye agberaga wọnyi; bi akoko ṣe n lọ, oke yii yoo tan; nitori gbogbo igba ni o n ko owo jade kuro ni ilẹ wa, ti ko si da ohunkohun pada ayafi egun Ọlọrun fun idokoowo ninu ohun ẹmi yii."

Laipẹ ti o pada wa si England, Wycliffe gba ipe lati ọdọ ọba lati jẹ olori ile ijọsin ti Lutterworth. Eyi jẹ idaniloju wipe ọba koi ti i binu si isọwọ-sọ-otitọ rẹ. Ari ipa Wycliffe ninu awọn ipinu ti wọn n ṣe ninu aafin ọba, ati ninu awọn igbagbọ orilẹ ede naa.

Laipẹ awọn ijọ paadi kọju ibinu si. A rán aṣẹ mẹta wa si England—si ile ẹkọ giga, si ọba ati si awọn alufa,—ti gbogbo wọn n paṣẹ pe ki a ṣa gbogbo ipa lati pa ẹlẹkọ odi yii lẹnu mọ. Ki aṣẹ yii to de, awọn bishọbu, ninu itara wọn, ti pe Wycliffe siwaju wọn fun igbẹjọ. Ṣugbọn meji ninu awọn ijoye ti wọn lagbara julọ ninu ijọba naa ni wọn tẹle wa si ibi igbẹjọ; ẹru ba awọn adajọ naa ti o fi jẹ wipe wọn dawọ eto igbẹjọ naa duro nigba ti o ṣe, nitori ọpọ awọn eniyan ti wọn yi ile igbẹjọ naa ka, ti wọn lọ ti wọn si n bọ, a jẹ ki o maa lọ ni alaafia. Laipẹ pupọ, Edward III, ẹni ti awọn alufa n wa ọna lati yi ọkan rẹ pada ni atako si Alatunṣe naa ni ọjọ ogbó rẹ ku, ẹni ti o n daabo bo Wycliffe tẹlẹ wa di adele fun ijọba naa.

Ṣugbọn awọn aṣẹ ti popu ran wa si gbogbo England ti o si fẹ ki a muṣẹ kankan sọ wipe ki a mu ẹlẹkọ odi naa ki a si ti i mọle. Awọn aṣẹ wọnyi n tọka taara si ibi ìdánásunni. O dabi ẹnipe Wycliffe yoo subu bi ẹran ije si ọwọ ibinu igbẹsan Romu. Ṣugbọn Ẹni ti O sọ fun ẹni igba atijọ ni wipe, "Ma bẹru: . . . Emi ni apata rẹ" (Jẹnẹsisi 15:1), tun na ọwọ Rẹ lati daabo bo iranṣẹ Rẹ. Ki i ṣe Alatunṣe naa ni iku mu lọ, bikoṣe popu ti o paṣẹ iparun rẹ. Gregory XI ku, awọn alufa ti wọn pejọ pọ lati ṣe igbẹjọ Wycliffe si tu ka.

Agbara Ọlọrun tun ṣiṣẹ ninu awọn iṣẹlẹ ni ọna ti o fun iṣẹ Atunṣe ni anfani lati dagba. A yan popu meji ti wọn jijọ n figagbaga si ori oye lẹyin iku Gregory. Awọn agbara meji ti wọn n kọju ija si ara wọn

yii, ti olukuluku si n sọ wipe òhun ko le baku wa n fẹ ki a ṣe igbọran si wọn. Olukuluku wọn n pe awọn olootọ lati ran oun lọwọ lati ba ikeji ja, wọn n fi egun buburu ti aṣẹ wọn lati tako ẹnikeji wọn lẹyin, wọn si n ṣe ileri ẹbun ni ọrun fun awọn atẹle won. Iṣẹlẹ yii ko ibaku nla ba agbara ijọ padi. Awọn ẹgbẹ mejeeji yii ṣe ohun gbogbo ti o wa ni ikawọ wọn lati kọ oju ija si ara wọn, fun igba diẹ, Wycliffe ni akoko fun isinmi. Egun ati ifẹsunkanni n kọja lọ lati ọdọ popu kan si ikeji, ti àgbárá ẹjẹ si n san lati le fi idi ọrọ wọn mulẹ. Rogbodiyan ati iwa ọdaran gbilẹ kan ninu ijọ. Ṣugbọn Alatunṣe naa ninu idakẹjẹ rẹ ni ile ijọsin rẹ ni Lutterworth n ṣiṣẹ takuntakun lati yi oju awọn eniyan kuro ni ọdọ awọn popu ti n ba ara wọn ja si ọdọ Jesu, Ọmọ alade Alaafia.

Iyapa yii, pẹlu gbogbo rogbodiyan ati iwa ibajẹ ti o fa, pese ọna silẹ fun iṣẹ Atunṣe nipa fifun awọn eniyan ni anfani lati ri ohun ti ijọ padi jẹ gan-an. Ninu iwe pelebe kan ti o tẹ jade, On the Schism of the Popes, (Lori iyapa laarin awọn Popu) Wycliffe pe gbogbo awọn eniyan lati wo o boya awọn alufa mejeeji yii ko sọ otitọ ni pipe ara wọn ni asodi si Kristi. O sọ wipe, “Ọlọrun ko ni jẹ ki ẹmi eṣu o jọba ninu alufa kan ṣoṣo mọ, ṣugbọn . . . O mu iyapa ba awọn meji, ki awọn eniyan, ni orukọ Kristi, le bori wọn pẹlu irọrun.”

Wycliffe, bi i ti Ọga rẹ, waasu iyinrere si awọn otoṣi. Titan imọlẹ naa ka ninu ile awọn ọmọ ijọ rẹ ni Lutterworth ko tẹ ẹ lọrun, o pinnu pe a nilati tan an ka gbogbo England. Lati le ṣe eyi, o ko ẹgbẹ oniwaasu jọ, awọn ti wọn jẹ olootọ ati olufọkansin, ti wọn fẹran otitọ, ti wọn si fẹran ki wọn tan an kalẹ ju ohunkohun lọ. Awọn wọnyi lọ si ibi gbogbo, wọn n kọni ni aarin ọja, ni awọn adugbo awọn ilu nla, ati ninu awọn ileto. Wọn wa awọn arugbo, awọn alaisan, ati awọn otoṣi lọ, wọn si n ṣi iroyin ayọ oore ọfẹ Ọlọrun fun wọn.

Gẹgẹ bi ọjọgbọn ninu ẹkọ ọrọ Ọlọrun ni Oxford, Wycliffe n waasu ọrọ Ọlọrun ninu awọn gbọngan ile ẹkọ giga naa. O fi tọkantọkan waasu otitọ fun awọn akẹkọ abẹ rẹ debi pe wọn fun ni àpèlé “onisẹgun iyinrere.” Ṣugbọn iṣẹ rẹ ti o tobi julọ ni bi o ti ṣe itumọ Iwe Mimọ si ede oyinbo. Ninu iṣe kan ti o pe ni, On the Truth and Meaning of the Scripture, (Lori Otitọ ati Itumọ Iwe Mimọ) o sọ nipa erongba rẹ lati ṣe itumọ Bibeli, ki gbogbo eniyan ni England ba a le ka iṣẹ iyanu Ọlọrun ni ede ti a gbe bi wọn.

Ṣugbọn lojiji a da iṣẹ rẹ duro. Bi o tilẹ jẹ wipe koi ti i to ọmọ ọgọta ọdun, iṣẹ àṣeìwẹyìn, ẹkọ, ati ipenija awọn ọta rẹ ṣe e lópò, wọn si jẹ ki o di arugbo laitọjọ. Aisan ti o lewu ni o kọ lu u. Iroyin yii mu ayọ ba awọn alufa onibara. Ni akoko yii, wọn ro wipe yoo ronupiwada nitori iwa ibi ti o wu si ijọ, wọn si yara kankan lọ si iyẹwu rẹ lati lọ gbọ iẹwọ

ẹṣẹ rẹ. Awọn aṣoju lati inu ẹgbẹ ẹsin mẹrẹẹrin, pẹlu awọn alakoso mẹrin ni wọn yi ọkunrin ti wọn ro wipe o n ku lọ yii ka. Wọn sọ wipe: “Iku ni o wa ni ẹnu rẹ yii, jẹ ki awọn aṣiṣe rẹ o fi ọwọ ba ọ lọkan, ki o si ko awọn ọrọ ti o ti sọ ni ipalara wa jẹ niwaju wa.” Alatunṣe naa tẹti silẹ pẹlu idakẹjẹ; o ni ki awọn ti wọn n tọju òhun o gbe oun dide joko ni ori ibusun oun, o tẹ oju mọ wọn bi wọn ti n reti ki o ko ọrọ rẹ jẹ, pẹlu ohùn nla ti o maa n dẹru ba wọn, o sọ wipe: “Emi ki yoo ku bikoṣe yiye; lati kede iwa ibi awọn alufa oníbárà.” Pẹlu itiju ati iyalẹnu, awọn alufa wọnyi yára kankan kuro ninu iyẹwu rẹ.

Awọn ọrọ Wycliffe wa si imuṣẹ. O wa laaye lati fi ohun ija ti o lagbara julọ lati kọju ija si Romu le ọwọ awọn ọmọ orilẹ ede rẹ lọwọ—lati fun wọn ni Bibeli, aṣoju ti Ọrun yan lati ṣe itusilẹ, ilalọyẹ ati ijere ọkan awọn eniyan. Awọn idena ti wọn tobi ti wọn si pọ ni o wa lati la kọja lati le ṣe iṣẹ yii. Aisan bo Wycliffe mọlẹ; o mọ wipe ọdun diẹ ni o ku fun ohun lati ṣiṣẹ; o ri awọn atako ti yoo doju kọ; ṣugbọn o tẹsiwaju laibẹru, pẹlu atilẹyin awọn ileri ọrọ Ọlọrun. Pẹlu okun agbara ironu rẹ ti o peye, ti o si kun fun iriri, agbara Ọlọrun pataki ti pa a mọ, o si ti pese rẹ silẹ fun eleyii, eyi ti o tobi julọ ninu awọn iṣẹ rẹ. Nigba ti rogbodiyan gba awọn ilẹ ti n ṣe ẹsin Kristẹni kan, Alatunṣe naa, ni ibi iṣẹ rẹ ni Lutterworth, laikọbi ara si iji ti n ja ni ìta, fi ara rẹ jin fun iṣẹ ti o yan laayo.

Lẹyin-ọrẹyin, iṣẹ naa pari—Bibeli akọkọ ti a tumọ ni ede Gẹẹsi. A ṣi ọrọ Ọlọrun silẹ fun England. Alatunṣe naa ko bẹru ina tabi ẹgba ẹwọn mọ nisinsinyii. O ti gbe ina ti a ko le pa ku si ọwọ awọn eniyan England. Ni fifun awọn eniyan orilẹ ede rẹ ni Bibeli, o ṣe iṣẹ lati ja ẹwọn aimọkan ati iwa ibajẹ, lati tu orilẹ ede rẹ silẹ ati lati fa wọn soke, ju eyi ti iṣẹgun ti o dara julọ lori papa ogun le ṣe lọ.

Nitori ti a koi ti i jagbọn iwe titẹ, nipasẹ iṣẹ ti n yọlẹ to si n ko aarẹ bani nikan ni a file sọ ẹda Bibeli di pupọ. Ifẹ awọn eniyan lati ni iwe naa pọ debi pe ọpọlọpọ ni wọn fi tayọtayọ funra wọn da a kọ, ṣugbọn pẹlu inira ni awọn ti n da a kọ fi le fun awọn ti wọn fẹ ra a ni iye ti wọn n fẹ. Diẹ lara awọn ọlọrọ ti wọn fẹ ra a fẹ lati ni gbogbo Bibeli naa. Awọn miran fẹ abala diẹ. Ni ọpọlọpọ igba awọn idile diẹ a para pọ lati ra odindi kan. Bayi ni Bibeli Wycliffe ṣe ri aaye wọ inu ile awọn eniyan.

Ipenija lati ronu ji wọn dide kuro ninu gbigba awọn ẹkọ ijọ paadi laiwoye. Wycliffe wa n kọni ni awọn ikọni ti wọn mu ki igbagbọ Protestant o yatọ—igbala nipa igbagbọ ninu Kristi, ati wipe Iwe Mimọ nikan ni ko le baku. Awọn oniwaasu ti o ran jade pin Bibeli ati awọn iwe Alatunṣe naa ka, wọn si ṣe aṣeyọri debi pe idaji awọn eniyan England ni wọn fẹrẹ gba igbagbọ tuntun yii.

Bi Iwe Mimọ ti jade kó iporuuru ọkan ba awọn alaṣẹ ijọ. Bayi wọn nilati doju kọ aṣoju ti o lagbara ju Wycliffe lọ—aṣoju ti ohun ija wọn kò lè ni agbara lé lórí. Ko si ofin kankan ti o de Bibeli ni England ni akoko yii, nitori ti a koi tii tẹ ẹ jade ni ede awọn eniyan ri. A ṣe iru awọn ofin wọnyi nigba ti o yá, a si lo wọn gidigidi. Sibẹsibẹ, pẹlu gbogbo awọn akitiyan awọn alufa, fun igba diẹ, akoko wa lati pin ọrọ Ọlọrun kaakiri.

Awọn adari ijọ paadi tun pa ète miran lati pa Alatunṣe naa lẹnu mọ. A pe e siwaju igbimọ igbẹjọ lẹẹmẹta ni sisẹ n tẹle, ṣugbọn wọn ko ri aṣeyọri kan. Ni akoko igbimọ awọn biṣọbu sọ wipe awọn iwe rẹ ni ẹkọ odi, nipa jijere ọba ọdọmọde ni, Richard II si ọdọ wọn, wọn gba aṣẹ ọba lati ti gbogbo awọn ti wọn ba gbagbọ ninu awọn ikọni ti a ko fẹ yii mọlé.

Wycliffe pe ẹjọ kotẹmilọrun lati ọdọ igbimọ awọn biṣọbu lọ si ile igbimọ aṣofin; laibẹru, o pe awọn oloye ijọ lẹjọ niwaju igbimọ orilẹ ede, o si beere ki a ṣe atunṣe si awọn aṣiṣe nla ti ijọ fi ọwọ si. Pẹlu agbara ifọrọyeni, o fi ijẹgaba ati iwa ibajẹ ijọ paadi han. Idarudapọ de ba awọn ọta rẹ. A ti fi ipa mu awọn ọrẹ ati alatilẹyin Wycliffe lati fa sẹyin, a si ti fi igboya reti wipe Alatunṣe naa, ni ọjọ ogbé rẹ, laini ọrẹ ati ni ohun nikan, yoo tẹriba fun apapọ aṣẹ ọba ati ti ijọ. Ṣugbọn dipo eyi, awọn atẹle popu ni wọn ri ijakulẹ. Igbimọ aṣofin taji si awọn ọrọ alagbara ti Wycliffe sọ, wọn yi aṣẹ oninunibini naa pada, Alatunṣe naa si wa ni ominira.

A tun pe e fun igbẹjọ ni igba kẹta, ni akoko yii, siwaju ajọ igbẹjọ ẹsin ti o ga julọ ni orilẹ ede naa. Nibi a ko ni fi aanu han fun ẹkọ odi. Romu yoo ri iṣẹgun nibi ni ikẹyin, a o si dawọ iṣẹ Alatunṣe naa duro. Bi awọn atẹle popu ti rò niyi. Bi wọn ba le mu erongba wọn ṣẹ, yoo pan dandan fun Wycliffe lati yan boya ki o kọ awọn ikọni rẹ silẹ, tabi ki o fi aafin silẹ lọ si inu ina.

Ṣugbọn Wycliffe ko yi ọrọ rẹ pada; ko ni dibọn. Laifoya o fi idi awọn ikọni rẹ mulẹ o si fọn awọn ẹsun ti awọn oninunibini rẹ fi kan-an kaá. Laiwo ara rẹ, ipo rẹ, ati ibi ti o wa, o pe awọn olugbọ reẹ siwaju ibujoko igbẹjọ Ọlọrun, ki wọn si wọn ẹtan ati arumọjẹ wọn wo ninu iwọn otitọ ayeraye. A ni imọlara agbara Ẹmi Mimọ ninu yara igbimọ naa. Agbara lati ọrun wa ṣubu lu awọn olugbọ rẹ. O dabi ẹnipe wọn ko ni agbara lati kuro nibẹ. Ọrọ Alatunṣe naa wọ inu ọkan wọn bi ọfa lati inu apó Oluwa. Pẹlu agbara iṣọwọsọrọ ti o ga o da ẹsun ẹkọ odi ti a fi kan-an pada lu wọn. O beere, kini o fun wọn ni igboya lati tan awọn aṣiṣe wọn kalẹ? Nitori èrè, ẹ n ta oore ọfẹ Ọlọrun?

Nikẹyin, o sọ pe "Tani ẹ ro wipe ẹ n ba ja? agbalagba ti o ti sunmọ eti iboji? Rara! pẹlu Otitọ—Otitọ ti o tobi ju yin lọ, yoo si bori yin." Lẹyin ti o sọ eyi tan, o kuro ninu ajọ naa, kò sì sí ọkan ninu awọn ọta rẹ ti o da a duro.

Iṣẹ Wycliffe ti fẹrẹ pari; ọpagun otitọ ti o ti gbe fun igba pipẹ yoo bọ kuro ni ọwọ rẹ laipẹ; ṣugbọn lẹẹkan si yoo ṣe ijẹri si iyinrere. A yoo polongo otitọ naa ni ile iṣọ agbara ijọba ẹtan. A pe Wycliffe lati wa jẹjọ niwaju igbimọ igbẹjọ popu ni Romu, igbimọ ti o ti fi ọpọ igba ta ẹjẹ awọn eniyan mimọ silẹ. Ko ṣe aimọkan nipa ewu ti o fẹ wu u, sibẹ i ba lọ bi kii ba ṣe gìrì arun ẹgba ti o di i lọwọ lati lọ si irin ajo naa. Ṣugbọn bi o tilẹ jẹ wipe a ko ni gbọ ohùn rẹ ni Romu, o le sọrọ pẹlu lẹta, eyi ni o si pinnu lati ṣe. Lati inu ile ijọsin rẹ, Alatunṣe naa kọ iwe si popu, eyi ti o kọ pẹlu apọnle ati ẹmi Kristẹni, ṣugbọn ti o ṣe ibawi ti o nipọn si iwuga ati igberaga popu.

O sọ wipe, "Nitootọ inu mi dun lati kede igbagbọ ti mo gba fun gbogbo eniyan, ati ni pataki julọ si bịṣọbu Romu: nitori bi mo ti ro wipe o peye ti o si jẹ otitọ, yoo fi tọkantọkan fi idi igbagbọ mi yii mulẹ, tabi bi o ba jẹ èké, yoo ṣe atunṣe rẹ.

"Ni akọkọ, emi ro wipe iyinrere Kristi ni akotan gbogbo ofin Ọlọrun. . . . Emi si ro wipe bịṣọbu Romu, niwọn igba ti o jẹ wipe oun ni aṣoju Kristi ni aye yii, yoo ṣe igbọran si ofin iyinrere yii ju ẹnikẹni lọ. Nitori titobi laarin awọn ọmọ ẹyin Kristi kii ṣe nipa ọla ati ọrọ aye yii, ṣugbọn ni sisunmọ ati titẹle Kristi ninu igbesi aye ati iwa Rẹ laiyẹṣẹ. . . . Ni akoko irin ajo Rẹ nihin yii, Kristi jẹ otoṣi; O ṣaata iṣakoso ati ọrọ aye, O si korira rẹ. . . .

"Ko si onigbagbọ kan ti o yẹ ki o tẹle popu funra rẹ tabi eyikeyi ninu awọn eniyan mimọ, ayafi ni bi o ba ṣe tẹle Jesu Kristi Oluwa; nitori Peteru ati awọn ọmọ Sebede, nipa fifẹ ọrọ aye, eyi ti o tako apẹẹrẹ Kristi, wọn dẹṣẹ, nitori naa a ko gbọdọ tẹle wọn ninu awọn aṣiṣe wọnyi. . . .

"O yẹ ki Popu o fi gbogbo aṣẹ ati iṣakoso aye silẹ fun awọn alaṣẹ aye, ki o si gba gbogbo awọn alufa rẹ niyanju daradara lati ṣe bẹẹ; nitori bẹẹ ni Kristi ati ni paapa julọ awọn apostoli Rẹ ti ṣe. Nitori naa bi mo ba ṣẹ ninu awọn nnkan wọnyi, mo fi tọwọtọwọ tẹriba lati ṣe atunṣe, ani titi de iku bi a ba nilo lati ṣe bẹẹ; bi mo ba sile fi ara mi ṣiṣẹ gẹgẹ bi ero ọkan tabi ifẹ mi, n ba funra ra mi wa siwaju bịṣọbu Romu; ṣugbọn Ọlọrun bẹmiwo ni ọna ti o yatọ, O si ti kọ mi lati ṣe igbọran si Ọlọrun ju eniyan lọ."

Ni akotan o sọ wipe: "Ẹ jẹ ki a gbadura si Ọlọrun wa, ki o ru ọkan Popu wa Urban VI soke, bi o ti bẹrẹ, wipe ki oun pẹlu awọn alufa rẹ le tẹle Jesu Kristi Oluwa ninu iwa ati iṣe; ki wọn ba a le kọ awọn eniyan daradara, ki awọn pẹlu le fi otitọ tẹle apẹẹrẹ wọn lati ṣe bẹẹ."

Ọna yii ni Wycliffe gba lati fi irẹlẹ ati ọkan tutu Kristi han popu ati awọn kadina rẹ, o fi iyatọ ti o wa laarin wọn ati Ọga ti wọn n sọ wipe wọn jẹ aṣoju Rẹ han wọn ati gbogbo awọn Kristẹni.

Wycliffe ni ireti kikun wipe ẹmi oun ni yoo jẹ ohun ti oun yoo fi silẹ nitori iṣotitọ oun. Ọba, popu ati awọn biṣọbu parapọ lati wa iparun rẹ, o si dabi ẹnipe lẹyin oṣu diẹ, a o mu lọ si ibi ti a o ti dana sun-un. Ṣugbọn ọkan rẹ kò mì. O sọ wipe, "Kilo de ti ẹ n sọrọ nipa wiwa ade ajẹriku ni ọna jijin rere?" "Ẹ waasu iyinrere Kristi si awọn alufa onigberaga, ijẹriku ko si ni baku lati ba a yin. En! Ki n wa laaye, ki n si dakẹ? . . . Rara o! Ẹ jẹ ki wahala o wa, mo duro de e."

Ṣugbọn agbara Ọlọrun tun daabo bo iranṣẹ Rẹ. Ẹni ti o fi gbogbo ọjọ aye rẹ fi igboya gbeja otitọ, pẹlu ewu ti o n wu ẹmi rẹ lojoojumọ, ko ni ṣubu labẹ ikorira awọn ọta rẹ. Wycliffe ko ṣa ipa lati daabo bo ara rẹ, ṣugbọn Oluwa ni o jẹ aabo rẹ; bayi nigba ti awọn ọta rẹ ri daju wipe wọn ni ẹran ijẹ wọn ni ikawọ wọn, Ọlọrun mu kuro ni arọwọto wọn. Ninu ile ijọsin rẹ ni Lutterworth, bi o ti fẹ pin ara Oluwa, o ṣubu nigba ti arun ẹgba kọ lu u, lẹyin akoko diẹ, o ku.

Ọlọrun ti fun Wycliffe ni iṣẹ rẹ. O fi ọrọ otitọ si lẹnu, o si daabo bo o ki ọrọ yii le de ọdọ awọn eniyan. A daabo bo ẹmi rẹ, a si jẹ ki iṣẹ rẹ o gun, titi ti a fi fi ipilẹ iṣẹ nla ti Atunṣe lelẹ.

Wycliffe wá lati inu okunkun Igba Oju Dudu. Ko si ẹni ti o ṣiṣẹ ṣaaju rẹ ti o le fi ṣe awokọṣe ilana atunṣe tirẹ. A gbe dide gẹgẹ bi Johanu Onitẹbọmi lati ṣe iṣẹ pataki kan, o nilati kede igba ọtun. Sibẹ ilana otitọ ti o gbe kalẹ peye o si wa ni iṣọkan; ti awọn Alatunṣe ti wọn tẹle ko kọja rẹ, awọn miran ko tilẹ de bẹ ani lẹyin ọgọrun ọdun. Ipilẹ ti a gbe kalẹ naa jin o si fẹ, ilana naa lagbara o si jẹ otitọ, ti o fi jẹ wipe awọn ti wọn wa lẹyin rẹ ko nilo lati tun un kọ.

Ẹgbẹ nla ti Wycliffe ko jọ, ti yoo ṣe idande fun ọkan ati oye awọn eniyan, ti yoo tu awọn orilẹ ede ti a ti de mọ ọkọ iṣẹgun Romu fun igba pipẹ silẹ, ní ipilẹ rẹ ninu Bibeli. Nibi ni a ti ri orisun omi iye ibukun, ti o san lati ọrundun kẹrinla titi de ọjọ iwaju, bi omi iye. Wycliffe fi igbagbọ gba Iwe Mimọ gẹgẹ bi ifihan ifẹ Ọlọrun ti a mi si, eyi ti o to lati ṣe odiwọn igbagbọ ati iṣesi. A ti kọ ọ lati ri Ijọ Romu gẹgẹ bi aṣẹ Ọlọrun ti ko le baku, ki o si fi tọwọtọwọ gba awọn ikọni ati aṣa ti a ti fi lelẹ fun ọpọ ọdun lai ni ibeere; ṣugbọn o yi oju kuro ninu gbogbo awọn nnkan wọnyi lati tẹti si ọrọ mimọ Ọlọrun. Aṣẹ yii ni o n rọ awọn eniyan lati gbà. Dipo ijọ ti o n sọrọ nipasẹ popu, o sọ wipe aṣẹ tootọ ni ohùn Ọlọrun ti n sọrọ nipasẹ ọrọ Rẹ. O tun kọ awọn eniyan wipe, ki i ṣe wipe Bibeli jẹ ifihan pipe nipa ifẹ Ọlọrun nikan, ṣugbọn Ẹmi Mimọ nikan ṣoṣo ni olutumọ rẹ, ati wipe gbogbo eniyan nilati kọ nipa ojuṣe ara rẹ funra rẹ nipa kikọ awọn ikọni rẹ. Ọna yii ni o gba lati yi ọkan awọn eniyan pada kuro ni ọdọ popu ati Ijọ Romu si inu ọrọ Ọlọrun.

Wycliffe jẹ ọkan lara awọn Alatunṣe ti wọn tobi julọ. Ni titobi laakaye, ni iṣọwọ ronu ti o mọ gaara, ni diduro gbọin pẹlu otitọ, ati ni gbigbeja rẹ pẹlu igboya, awọn perete ni wọn dabi rẹ ninu awọn ti wọn tẹle. Igbe aye iwa mimọ, aikaarẹ ninu ẹkọ ati iṣẹ, iṣotitọ ti ko le ṣègbè ati ifẹ bi i ti Kristi ati iṣotitọ ninu iṣẹ iranṣẹ ni wọn jẹ iwa Alatunṣe akọkọ. O si ni gbogbo iwọnyi pẹlu aimọkan ati iwa ibajẹ ti wọn gbilẹ kan ni akoko ti o dide.

Iwa Wycliffe jẹ ẹri si agbara Iwe Mimọ lati kọni ati lati yi ni lọkan pada. Bibeli ni o sọ ọ da ẹni ti o jẹ. Agbara lati ni oye awọn otitọ nla ifihan n fun ọgbọn orí ni isọdọtun ati agbara. O n lani lọyẹ, o n sọ ironu di pipe, o si n muni ṣe ipinu ti o mu ọgbọn dani. Ẹkọ Bibeli yoo gbe gbogbo ero, ifẹ ọkan ati afojusun eniyan ga ju eyikeyi ninu ẹkọ miran ti a le kọ lọ. O n fi idi erongba mulẹ, o n fun ni ni igboya, suuru, ati ipamọra; o n sọ iwa di ọtun o si n sọ ọkan di mimọ. Kikọ ẹkọ Iwe Mimọ tọwọtọwọ pẹlu ifọkansin, gbigbe oye akẹkọ wá tààrà siwaju òye ayereye, yoo fun araye ni awọn eniyan ti òye wọn gbooro ti o si n ṣiṣẹ, ti wọn ni erongba ti o dara, ju eyi ti ẹkọ ti o ga julọ ninu imọ eniyan le fun ni lọ. Onisaamu nì wipe, “Ifihan ọrọ Rẹ funni ni imọlẹ; o n fi oye fun awọn òpè.” O. Dafidi 119:130.

Awọn ẹkọ ti Wycliffe fi kọni n tan kalẹ lẹyin igba diẹ; awọn atẹle rẹ ti a mọ si Wycliffites ati Lollards, kò rìn kaakiri England nikan, ṣugbọn wọn fọn kaakiri lọ si awọn ilẹ miran, wọn gbe imọ iyinrere pẹlu wọn. Ni akoko yii ti a ti mu adari wọn kuro, awọn oniwaasu naa ṣiṣẹ pẹlu itara ti o ju ti tẹlẹ lọ, ti ọpọlọpọ si n rọ wá lati gbọ ikọni wọn. Awọn ọlọrọ, ani iyawo ọba, wa lara awọn ti wọn jèèrè ọkan wọn. Ni ọpọlọpọ ilu, a ri ami atunṣe ti o han gedegbe ninu iṣesi awọn eniyan, a si mu awọn ami ibọrisa ẹsin Romu kuro ninu awọn ile ijọsin. Ṣugbọn laipẹ, ìjì inunibini ti ko laanu bì lu awọn ti wọn ni igboya lati gba Bibeli gẹgẹ bi atọna wọn.

Lati le fi idi agbara wọn mulẹ nipa titẹle Romu, awọn ọba England ko lọra lati kọ oju ija si awọn Alatunṣe. Fun igba akọkọ ninu itan England, a pa aṣẹ lati dana sun awọn atẹle iyinrere. Ijẹriku n tẹle ijẹriku. Ọlọrun awọn ọmọ ogun nikan ni awọn akede otitọ ti a n da lẹbi ti a si n jẹniya lè kigbe si. A n dọdẹ wọn bi ọta ijọ ati aṣọtẹ si ilu, wọn tẹsiwaju lati waasu ninu awọn ibi ti o fi ara sin, wọn n ri ibugbe ninu ile awọn talaka, wọn si n sapamọ sinu awọn iho inu ilẹ ati iho inu apata ni ọpọlọpọ igba.

Laika ibinu inunibini si, igbogunti iwa ibajẹ ninu ẹsin igbagbọ ti o wọpọ ni akoko naa n lọ pẹlu suuru, ifọkansin ati laisi ariwo fun ọpọ ọdun. Oye awọn Kristẹni nipa otitọ ni akoko naa ko kun tó, ṣugbọn wọn kọ lati fẹran ati lati ṣe igbọran si ọrọ Ọlọrun,wọn si fi suuru

jiya nitori rẹ. Bi awọn ọmọ ẹyin ni akoko awọn apostoli, ọpọlọpọ ni wọn padanu ọrọ aye nitori iṣẹ Kristi. Awọn ti a gba laaye lati gbe ninu ibugbe wọn fi tayọtayọ gba awọn arakunrin wọn ti a le jade si ile wọn, nigba ti a ba si le awọn naa sita, wọn a fi tayọtayọ gba ìpín awọn alarinkiri. Lootọ ni wipe ọpọlọpọ ni wọn bẹru nitori ibinu awọn oninunibini, ti wọn kọ igbagbọ wọn silẹ lati le gba ominira wọn, ti wọn jade kuro ninu ọgba ẹwọn pẹlu aṣọ ironupiwada lọrùn lati kede ironupiwada wọn. Ṣugbọn ki i ṣe awọn eniyan perete—laarin awọn ọlọrọ ati awọn otoṣi—ni wọn fi igboya jẹri si otitọ ninu ile tubu, ninu "awọn ile Lollard," ati laarin ifiyajẹni ati ninu ina, ti wọn n yọ wipe a ka wọn yẹ lati mọ "ibakẹgbẹ ijiya Rẹ."

Awọn ọmọ ijọ paadi kuna lati ṣe ifẹ inu wọn si Wycliffe nigba aye rẹ, wọn ko sile tẹ ikorira wọn lọrun nigba ti ara rẹ ba si wa ni alaafia ninu iboji. Nipasẹ aṣẹ igbimọ Constance, ni ogoji ọdun lẹyin iku rẹ, a wu egungun rẹ sita, a dana sun-un nigbangba, a wa da eeru rẹ sinu odo ti o wa lẹba wọn. Onkọwe agba kan sọ wipe, "Odò yii ti gbe eeru rẹ lọ si Avon, lati Avon lọ si Severn, lati Severn lọ si inu awọn okun kekeeke, ati lati ibẹ lọ si inu agbami okun. Bayii ni eeru Wycliffe ti o jẹ ami awọn ikọni rẹ ṣe fọn kaakiri gbogbo aye." Awọn ọta rẹ ko ni oye pupọ nipa bi iwa ika wọn ti ṣe ni itumọ to.

Nipasẹ awọn iwe Wycliffe ni John Huss ti Bohemia fi kọ ọpọlọpọ awọn aṣiṣe ẹsin Romu silẹ ti o si bẹrẹ iṣẹ atunṣe. Bayi ni a ṣe gbin irugbin otitọ ni awọn orile ede mejeeji ti wọn jinna si ara wọn wọnyi. Lati Bohemia, iṣẹ naa tan de awọn ilẹ miran. Ọkan awọn eniyan yi si ọrọ Ọlọrun ti a ti gbagbe fun ọjọ pipẹ. Ọwọ Ọlọrun n pese ọna silẹ fun iṣẹ Atunṣe Nla.

6

Huss Ati Jerome

Ati gbin iyinrere si Bohemia lati ibẹrẹ ọrundun kẹsan. A ṣe itumọ Bibeli, a si n ṣe isin apapọ ni ede abinibi awọn eniyan. Ṣugbon bi agbara popu ti n pọ si, bẹẹ naa ni ọrọ Ọlọrun ṣe n fi ara sin. Gregory VII ti o ri bi ojuṣe rẹ lati sẹ igberaga awọn ọba rọ, tun ni erongba lati ko awọn eniyan ni igbekun pẹlu; nitori naa, a pa aṣẹ ti o sọ ọ di eewọ lati ṣe isin apapọ ni ede Bohemia. Popu sọ wipe “o tẹ Alagbara giga lọrun wipe ki a maa ṣe isin òun ni ede àìmọ, ati wipe ọpọlọpọ iwa buburu ati ẹkọ eke ni wọn ti jẹ jade nitori pe a ko ṣe igbọran si ofin yii.” Bayi ni Romu ṣe paṣẹ pe ki a pa ina ọrọ Ọlọrun ki a si ti awọn eniyan mọ inu okunkun. Ṣugbọn Ọrun ti pese awọn ọna miran silẹ lati pa ijọ mọ. Ọpọlọpọ awọn Waldenses ati Albigenses ti inunibini ni France ati Italy lé kuro ninu ile wọn wa si Bohemia. Bi o tilẹ jẹ wipe wọn ko le waasu ni gbangba, wọn fi itara ṣiṣẹ labẹlẹ. Bayi ni a ṣe pa igbagbọ tootọ mọ lati ọdun de ọdun.

Ṣaaju akoko Huss, awọn kan wa ni Bohemia ti wọn ṣe atako si awọn iwa ibajẹ inu ijọ ati iwa aibikita awọn eniyan ni gbangba. Ọpọ awọn eniyan ni wọn fiye si iṣẹ wọn. Eyi ru ibẹru awọn oloye ijọ soke, a si bẹrẹ inunibini si awọn ọmọleyin iyinrere. A le wọn lati jọsin ninu igbo ati awọn oke, awọn ẹgbẹgun dọdẹ wọn kaakiri, ọpọlọpọ ni wọn padanu ẹmi wọn. Lẹyin akoko diẹ, a paṣẹ wipe ki a dana sun gbogbo awọn ti wọn ba yapa kuro ninu ilana ẹsin Romu. Ṣugbọn nigba ti awọn Kristẹni n fi ẹmi wọn lelẹ, wọn n wọna fun iṣẹgun igbagbọ wọn. Ọkan lara awọn ti wọn n “kọni wipe nipa igbagbọ ninu Olugbala ti a kan mọgi nikan ni a file ri igbala,” sọ nigba ti o n ku wipe: “Ni akoko yii, ibinu awọn ọta otitọ n bori wa, ṣugbọn ki yoo ri bẹẹ titi lae; ẹnikan

yoo dide lara awọn eniyan lasan, laini ida tabi aṣẹ, wọn ki yoo si le bori rẹ." Akoko Luther si jina réré ni ọjọ iwaju; ṣugbọn ẹnikan ti n dide ná, ẹni ti ẹri rẹ si Romu yoo mi awọn orilẹ ede.

John Huss wa lati ile talaka, iku baba rẹ si tètè sọ ọ di alaini baba. Iya rẹ ti o jẹ olufọkansin, ri ẹkọ ati ibẹru Ọlọrun bi ohun ti o niyelori julọ ninu awọn ohun ini, o si wọna lati fun ọmọ rẹ ni ogún ini yii. Huss lọ si ile ẹkọ ti o wa ni ileto wọn, lẹyin eyi o lọ si ile ẹkọ giga ni Prague, o wọle gẹgẹ bi akẹkọ ti a ṣe itọrẹ aanu fun. Iya rẹ sin in lọ si Prague; opó ti o tun jẹ otoṣi, ko ni ọrọ aye kankan lati fifun ọmọ rẹ gẹgẹ bi ẹbun, ṣugbọn bi wọn ti n wọ inu ilu nla naa, o kunlẹ lẹgbẹ ọmọ alaini-baba naa o si gba adura ibukun Baba wọn ti n bẹ ni ọrun le lori. Iya rẹ ko ni imọ kikun nipa bi a yoo ti dahun adura rẹ.

Ninu ile ẹkọ giga, Huss ya ara rẹ sọtọ nipa ifọkansi laikaarẹ ati idagbasoke rẹ, nigba ti igbesi aye ailabawọn ati iwa tutu rẹ, pẹlu iwa ikonimọra rẹ mu ki gbogbo eniyan o bọwọ fun. O fi tọkantọkan gbagbọ ninu Ijọ Romu, o si n fi itara wa awọn ibukun ẹmi ti o n sọ wipe oun n fifun ni. Ni ọjọ ajọdun, o lọ lati ṣe ijẹwọ ẹṣẹ, o san awọn owo ẹyọ ti wọn ku ni ọwọ rẹ, o si tẹle awọn eniyan ti n to lọwọọwọ ki o baa le pin ninu idariji ti a ṣe ileri. Lẹyin ti o pari ẹkọ rẹ ni ile ẹkọ giga, o dara pọ mọ ẹgbẹ alufa, o si tete goke agba, laipẹ a gbe lọ si aafin ọba. A tun sọ ọ di ọjọgbọn, lẹyin eyi o di olori ile ẹkọ ti o ti kẹkọ jade. Laarin ọdun diẹ akẹkọ otoṣi ti a n ṣe itọrẹ aanu fun di ohun amuyangan fun orilẹ ede rẹ, ti oruko rẹ si di ilumọ-ọn ka ni ilẹ Europe.

Ṣugbọn ni abala miran ni Huss ti bẹrẹ iṣẹ atunṣe. Ni ọdun diẹ lẹyin ti o wọ inu ẹgbẹ alufa, a yan-an lati jẹ oniwaasu ninu ile ijọsin ti Bethlẹhẹmu. Ẹni ti o da ile ijọsin yii silẹ sọ ọ gẹgẹ bi ohun ti o ṣe pataki lati ṣe iwaasu Iwe Mimọ ni ede awọn eniyan.

Bi o tilẹ jẹ wipe Romu ṣe atako si, a ko dawọ rẹ duro patapata ni Bohemia. Ṣugbọn awọn eniyan jẹ òpè ninu Bibeli pupọpupọ, awọn iwa ibajẹ ti wọn buru julọ si gbilẹ laarin gbogbo eniyan. Huss ṣe ibawi awọn iwa buburu yii laipẹ ọrọ sọ, o si n tọka si ọrọ Ọlọrun lati fi idi ẹkọ otitọ ati iwa mimọ ti o n fi kọni mulẹ. Jerome, ọmọ ilu Prague, ti o jẹ ọrẹ pẹkipẹki fun Huss kó awọn iwe Wycliffe dani nigba ti o n ti England bọ. Ọbabinrin Engalnd, ẹni ti o gbagbọ ninu awọn ikọni Wycliffe, jẹ ọmọ ọba ni Bohemia, nipasẹ rẹ, iṣẹ Alatunṣe naa tan kalẹ ni ilẹ abinibi rẹ. Huss ka awọn iwe wọnyi pẹlu ifẹ ọkan; o gbagbọ wipe Kristẹni tootọ ni ẹni ti o kọ wọn o si fi oju rere wo awọn atunṣe ti o n waasu rẹ. Laimọ, Huss gbẹsẹ le ọna ti yoo dari rẹ jinna réré si Romu.

Laarin akoko yii, awọn alejo kan wa si Prague lati England, wọn jẹ ọmọwe to ti gba imọlẹ, wọn si wa lati tan-an kalẹ ni ilẹ jijina réré. Wọn bẹrẹ nipa titako aṣẹ Romu ni gbangba, laipẹ awọn alaṣẹ pa wọn lẹnu

mọ; ṣugbọn nitori pe wọn ko fẹ fi erongba wọn silẹ, wọn lo ọna miran. Wọn jẹ ayaworan bi wọn ti jẹ oniwaasu pẹlu, wọn tẹsiwaju lati lo imọ wọn. Ni ibi ojutaye kan, wọn ya aworan meji sibẹ. Ọkan ṣe afihan bi Kristi ti wọ Jerusalẹmu, "ni ọlọkan tutu ti o joko lori kẹtẹkẹtẹ" (Matiu 21:5), ti awọn ọmọ ẹyin rẹ tẹle laiwọ bata, pẹlu aṣọ ti o ti gbó nitori ìrìn àjò ni ọrun wọn. Aworan keji fi itolọwọọwọ popu han—popu wọ aṣọ olowo iyebiye ati ade onipele mẹta, o gun ẹṣin ti a ṣe lọṣọ gidigidi, awọn kadina ati awọn alufa rẹ tẹle lẹyin pẹlu aṣọ ti n dan.

Eyi jẹ iwaasu ti gbogbo awọn eniyan fiye si. Ọgọọrọ awọn eniyan n wa lati wo awọn aworan wọnyi. Ko si ẹni ti ko mọ itumọ rẹ, ọpọlọpọ ni wọn si ni imọlọkan ti o jinlẹ nipa iyatọ ti o wa ni aarin irẹlẹ ati ọkan tutu Kristi Oluwa ati igberaga ati ìrera popu ti o pe ara rẹ ni atẹle Rẹ. Idarudapọ nla deba Prague, lẹyin igba diẹ, awọn alejo yii ri wipe o ṣe pataki fun wọn lati fi ilu naa silẹ nitori aabo ara wọn. Ṣugbọn a ko le gbagbe ẹkọ ti wọn ti kọni. Awọn aworan naa mu Huss lọkan pupọpupọ, o si mu ki o tubọ kọ ẹkọ Bibeli ati awọn iwe Wycliffe si. Bi o tilẹ jẹ wipe titi di akoko yii, koi tii mura silẹ lati gba gbogbo atunṣe ti Wycliffe waasu rẹ, o ri ilana ijọ paadi ni bi o ti ri gan-an, o si fi itara ti o gbona si ṣe ibawi si igberaga, oju kokoro ati iwa ibajẹ awọn olori ijọ.

Imọlẹ naa tan de Germany lati Bohemia, nitori rukerudo ti o ṣẹlẹ ni ile ẹkọ giga ni Prague mu ki ọpọlọpọ awọn ọmọ Germany o pada sile. Ọpọlọpọ ni wọn ni imọ wọn akọkọ nipa Bibeli lati ọdọ Huss, nigba ti wọn si n pada si ilẹ baba wọn, wọn tan iyinrere naa kalẹ.

Iroyin iṣẹ ti n lọ ni Prague de Romu, laipẹ, a pe Huss lati wa fi ara han ni Romu. Lati jẹ ipe yii tumọ si wipe o fi ara rẹ si ọwọ iku ti o daju. Ọba ati ayaba Bohemia, ile ẹkọ giga, awọn ijoye, ati awọn alaṣẹ ijọba wa parapọ lati ṣipẹ si popu pe ki o gba Huss laaye lati duro ni Prague ki o si ran aṣoju lati fi ara han ni Romu. Dipo ki o gba ipẹ yii, popu tẹsiwaju lati ṣe igbẹjọ Huss, o si da a lẹbi, o wa yọ gbogbo ilu Prague kuro ninu ijọ.

Ni akoko naa, ibikibi ti a ba ṣe iru idajọ yii fun, o maa n fa ibẹrubojo. Awọn isin ti a maa n fi n gbe e lẹsẹ jẹ eyi ti a maa n ṣe ni ọna ti yoo ko ipaya ba awọn ti n wo popu gẹgẹ bi aṣoju Ọlọrun funra Rẹ, ti o ni kọkọrọ ọrun ati ipo oku, ti o si ni agbara lati ṣe idajọ ti ara ati ti ẹmi. Awọn eniyan gbagbọ wipe a ti ilẹkun ọrun mọ agbegbe ti a ba ṣe idajọ yii le lori; ati pe titi fi di igba ti o ba tẹ popu lọrun lati mu aṣẹ yii kuro, a yoo ti ilẹkun ibi igbadun mọ awọn ti wọn bá kú. Ni idaniloju fun ajalu nla yii, a dawọ gbogbo eto ẹsin duro ni agbègbè naa. A ti awọn ile ijọsin pa. A n ṣe eto igbeyawo ni agbala ile ijọsin. A ko jẹ ki a sin awọn oku sori ilẹ ti a ya si mimọ, ṣugbọn a sin wọn sinu koto tabi sinu oko laisi eto isinku. Romu wa n ṣe akoso ọkan awọn eniyan nipasẹ

awọn ohun ti wọn bu mọ eniyan lọkan wọnyi. Ilu Prague kun fun rogbodiyan. Ọpọ awọn eniyan da Huss lẹbi gẹgẹ bi okunfa gbogbo ajalu wọn, wọn si sọ wipe ki a jọwọ rẹ lọwọ fun igbẹsan Romu. Ki ìjì naa baa le dawọ duro, Alatunṣe naa pada si ileto abinibi rẹ fun igba diẹ. O kọ iwe si awọn ọrẹ rẹ ti o fi silẹ ni Prague wipe: "Bi mo ba kuro laarin yin, nitori ati lè tẹle ilana ati apẹẹrẹ Jesu Kristi ni, lati maṣe gba awọn ti ọkan wọn n ṣojo laaye lati fa idalẹbi ayeraye si ori ara wọn, ati lati maṣe jẹ okunfa ijiya ati inunibini fun awọn olufọkansin. Mo tun kuro nitori ibẹru pe awọn alufa aliwabiọlọrun le ma gba iwaasu ọrọ Ọlọrun laaye laarin yin; ṣugbọn emi kò kuro lọdọ yin lati sẹ otitọ mimọ, eyi ti mo ṣetan lati ku nitori rẹ, pẹlu iranlọwọ Ọlọrun." Huss ko dawọ iṣẹ rẹ duro, ṣugbọn o n rinrin ajo lọ si awọn ileto ti wọn wa ni ayika, o n waasu fun awọn èrò ti wọn ṣetan lati gbọ ọ. O wa ṣẹlẹ wipe ọna ti Romu lo lati tẹ iyinrere rì wa jẹ ọna ti o fi tàn kalẹ si daradara. "A ko le ṣe ohunkohun lati tako otitọ, ayafi lati gbè ti i." 2 Korintin 13:8.

"Ninu ipele yii ninu iṣẹ rẹ, o dabi ẹnipe ọkan Huss kun fun ijakadi kikoro. Bi o tilẹ jẹ wipe ijọ n wa ọna lati fi agbara rẹ da a lágara, koi tii kọ aṣẹ rẹ silẹ. O si gba wipe Ijọ Romu ni aya Kristi, popu si ni aṣoju Ọlọrun. Ki i ṣe ipilẹ ẹkọ funra rẹ ni Huss kọ oju ija si, bikoṣe ìlòkulò agbara. Eyi da ijakadi kikan silẹ laarin ohun ti o mọ ati ẹri ọkan rẹ. Bi aṣẹ naa bá pé, ti ko sile baku, gẹgẹ bi o ti gbagbọ wipe o ri, kilo de ti ọkan rẹ n fẹ lati ṣe aigbọran si? O ri wipe ṣiṣe igbọran si jasi ẹṣẹ; ṣugbọn kilo de ti igbọran si aṣẹ ijọ ti ko le baku ṣe di ọran nla bayii? Eyi jẹ isoro ti ko ri idahun si; eyi jẹ ohun ti o n da a lamu nigba gbogbo. Ohun ti o ri ti o sunmọ idahun julọ ni wipe o ti tun ṣẹlẹ, gẹgẹ bi o ti ṣẹlẹ ṣaaju ni akoko Olugbala, ti awọn alufa ijọ di eniyan buburu, ti wọn si n lo aṣẹ wọn ti o tọna fun ohun ti ko tọ. Eyi dari rẹ lati gba ikọni wipe ẹkọ Iwe Mimọ ti eniyan ba ni oye rẹ ni o yẹ ki o ṣe akoso ọkan; o gba eyi fun itọsọna ara rẹ, o si n waasu rẹ lati jẹ itọsọna fun awọn miran; ni ọna miran ẹwẹ, ki i ṣe ijọ ti n sọrọ nipasẹ awọn alufa, bikoṣe Ọlọrun ti o n sọrọ ninu Bibeli, ni itọsọna ti ko le baku."

Lẹyin ti rukerudo ilu Prague sẹrọ, Huss pada si ile ijọsin rẹ ni Prague lati waasu ọrọ Ọlọrun pẹlu itara ati igboya ti o pọ si. Awọn ọta rẹ ni agbara, wọn si n ṣiṣẹ, ṣugbọn ayaba ati ọpọ ninu awọn ijoye jẹ ọrẹ rẹ, ọpọ awọn eniyan ni wọn si ti i lẹyin. Ni fifi ikọni rẹ ti ko labawọn ti o si buyì kunni, ati igbe aye iwa mimọ rẹ wé awọn ikọni ti wọn n rẹnisilẹ ti awọn atẹle Romu n waasu rẹ, ati iwa ifẹ owó ati iwa aikora-ẹni-nijanu wọn wé ara wọn, ọpọ ri wipe ohun ti o buyi kunni ni lati gbe ti i lẹyin.

Titi di akoko yii, Huss nikan ni o n da ṣe iṣẹ rẹ; ṣugbọn ni akoko yii Jerome, ẹni ti o gba awọn ikọni Wycliffe nigba ti o wa ni England,

wa dara pọ mọ iṣẹ atunṣe. Lati akoko yii lọ, awọn mejeeji jijọ wa ni iṣọkan ninu igbesi aye wọn, wọn ko si pinya ninu iku. Òye ti o já fáfá, ẹbun ọrọ sisọ, ati ẹkọ—awọn ẹbun ti wọn n jẹ ki a fẹran ẹni—ni Jerome ní ní àrà ọtọ; ṣugbọn Huss ní awọn ẹbun ti wọn fi okun ìwà hàn ju u lọ. Isọwọronu ní pẹlẹkutu rẹ ká ẹmi wiwuwa laironu Jerome lọwọ kò, oun naa mọ ìwúlò rẹ, o si n fi irẹlẹ gba awọn imọran rẹ. Atunṣe naa tubọ tan kalẹ si labẹ ajumọ ṣiṣẹ pọ wọn.

Ọlọrun fi aaye gba imọle nla lati tan si ọkan awọn eniyan pataki yii, O fi ọpọlọpọ awọn aṣiṣe Romu han wọn; ṣugbọn wọn ko gba gbogbo imọlẹ ti o yẹ ki a fun araye. Nipasẹ awọn iranṣẹ Rẹ wọnyi, Ọlọrun n dari awọn eniyan Rẹ kuro ninu okunkun ẹsin Romu; ṣugbọn ọpọlọpọ idena nla ni wọn yoo ba pade, O si n dari wọn ni sisẹ ntẹle, bi wọn ti le fi ara da a. Wọn ko ṣetan lati gba gbogbo imọlẹ naa ni ẹẹkan ṣoṣo. Bi a ba fifun wọn, yoo mu ki wọn yipada bi ogo oorun ọsan gangan ti n ṣe si awọn ti wọn ti wa ninu okunkun fun igba pipẹ. Nitori naa O fi han awọn adari naa diẹdiẹ, bi awọn eniyan a ti ṣe le gba a. Lati ọdun de ọdun, awọn ọṣiṣẹ olootọ miran yoo tẹle wọn lati dari awọn eniyan siwaju si sí oju ọna atunṣe.

Iyapa inu ijọ si n tẹsiwaju. Awọn popu mẹta ni wọn wa n ja fun ipo, ijakadi wọn si fi rudurudu ati iwa ọdaran kun inu ẹsin Kristẹni. Nigbati fifi ara ẹni gegun ko tẹ wọn lọrun, wọn bẹrẹ si ni lo ohun ija oloro. Olukuluku wọn ni o n wa ọna lati ra ohun ija ati lati ri awọn ọmọ ogun. Wọn nilo owo; lati le ri eyi, wọn sọ awọn ẹbun, ipo ati ibukun ijọ di tita. Awọn alufa pẹlu tẹle apẹẹrẹ awọn ọga wọn, wọn n ta awọn ohun to ni i ṣe pẹlu ijọ, wọn n ja ogun lati le fi idi ẹni ti o n ba wọn figagbaga rẹmi, ati lati le fi idi agbara wọn mulẹ. Pẹlu igboya ti n pọ si lojoojumọ Huss waasu tako awọn iwa eeri ti a fi aaye gba ni orukọ ẹsin; awọn eniyan si fi ẹsun kan awọn adari ijọ Romu ni gbangba gẹgẹ bi okunfa awọn idamu ti wọn bo ẹsin Kristẹni kikankikan.

O tun dabi ẹnipe ilu Prague n sunmọ bèbè ijakadi ti o le fa itajẹsilẹ. Bi o ti ṣẹlẹ latẹyin wa, a fi ẹsun kan iranṣẹ Ọlọrun gẹgẹ bi "ẹni ti n yọ Israeli lẹnu." 1 Awọn Ọba 18:17. A tun yọ gbogbo ilu naa kuro ninu ijọ, Huss tun pada si abule rẹ. Ijẹri ti o fi ootọ inu ṣe ninu ile ijọsin rẹ ni Bẹthlẹhẹmu ti pari. Yoo sọrọ si gbogbo awọn Kristẹni lati ibi ti o fẹ si, ki o to fi ẹmi rẹ lelẹ gẹgẹ bi ẹri fun otitọ.

Lati le dawọ iwa ibi ti o n da Europe laamu duro, a pe ajọ gbogboogbo kan si ilu Constance. Ọba Sigismund ni o pa a laṣẹ ki ọkan lara awọn popu ti wọn n ja fun ipo, John XXIII, o pe ipade naa. Ipe fun ipade naa ko tẹ Popu John lọrun rara, nitori iwa ati iṣesi rẹ ko le yege bi a ba ṣe iwadi wọn, ani bi o ba tilẹ jẹ wipe awọn alufa ti iwa

wọn ko mọ bi ti awọn ọmọ ijọ ni akoko naa ni wọn ṣe e. Ṣugbọn ko tobẹ ki o tako ifẹ Sigismund.

Awọn ohun pataki ti ipade naa yoo ṣe ni lati wa ojutu si iyapa ti o wa ninu ijọ ati lati fa ekọ odi tu. Nitori naa a pe awọn popu mejeeji ti wọn n tako ara wọn lati wa fi ara han niwaju rẹ, a tun pe aṣiwaju awọn ti wọn n kọ ẹkọ tuntun, John Huss pẹlu. Awọn popu mejeeji ko wa nitori ti wọn fẹ daabo bo ẹmi ara wọn, ṣugbọn wọn ran aṣoju wa. Popu John, ẹni ti a mọ wipe oun ni o pe ipade naa, wá pẹlu awọn iyemeji, o n ro boya erongba inu ọba ni lati yọ oun nipo, o si n bẹru ki a maṣe ṣe iwadi awọn iwa ọdaran ti o fi ko itiju bá ade ijọ, ati iwa ọdaran ti o fi gba ade naa. Sibẹ pẹlu ọla nla ni o fi wọ inu ilu Constance, ti awọn ijoye nlanla inu ijọ ati awọn iranṣẹ aafin tẹle. Gbogbo awọn alufa ati ijoye inu ilu naa, pẹlu ọgọọrọ awọn ero ni wọn jade lọ pade rẹ. Ìbòrí igunwa oniwura ti awọn alaṣe ilu mẹrin gbe dani ni a fi bo o lori. A gbe akara ti a ya si mimọ dani niwaju rẹ, ti aṣọ olowo iyebiye awọn kadina ati ti awọn ijoye jẹ ki ibẹ o lẹwa gidigidi.

Ṣugbọn arinrin ajo kan n sunmọ Constance. Huss mọ awọn ewu ti wọn le wu oun. O kuro ni ọdọ awọn ọrẹ rẹ bi ẹnipe wọn ko ni pade mọ, o si mu ọna rẹ pon ti oun ti ero wipe ó n mu oun lọ si ibi idana-sunni. Bi o tilẹ jẹ wipe o gba iwe idaabobo kan lọwọ ọba Bohemia, ti o tun gba omiran lọwọ Sigismund ninu ajo rẹ, o ṣe ohun gbogbo silẹ bi ẹnipe iku le de.

Ninu iwe kan ti o kọ si awọn ọrẹ rẹ ni Prague, o sọ pe: “Ẹyin ara mi, . . . mo n lọ pẹlu iwe idaabobo lati ọwọ ọba lati lọ pade awọn ọta mi ti wọn pọ niye ti wọn ko si dẹyin. . . . Mo fi gbogbo igbẹkẹle mi sinu Ọlọrun alagbara, sinu Olugbala mi; mo gbagbọ wipe yoo tẹti si adura atọkanwa yin, wipe yoo fi ọgbọn ati oye Rẹ si mi lẹnu ki n baa le doju ija kọ wọn; ki O si fun mi ni Ẹmi Mimo Rẹ lati le fun mi ni okun ninu otitọ, ki n le fi igboya doju kọ idanwo, ọgba ẹwọn ati bi o ba pan dandan, iku oró. Jesu Kristi jiya fun awọn ayanfẹ Rẹ; nitori naa ṣe o yẹ ki o ya wa lẹnu wipe O fi apẹẹrẹ lelẹ fun wa bi, ki awa pẹlu baa le fi suuru fi ara da ohun gbogbo nitori igbala wa? Oun ni Ọlọrun, awa si ni ẹda Rẹ; Oun ni Oluwa, awa si ni iranṣẹ Rẹ; Oun ni Oluwa gbogbo aye, awa si jẹ otoṣi ẹlẹran ara—sibẹ O jiya! Kilo wa de ti awa pẹlu ko fi nilati jiya, niwọn igba ti ijiya wa fun ifọmọ wa? Nitori naa ẹyin ololufẹ, bi iku mi yoo ba fi kun ogo Rẹ, ẹ gbadura ki o yara wa kankan, ki O si ran mi lọwọ lati fi ara da gbogbo wahala mi pẹlu iduroṣinṣin. Ṣugbon bi pipada mi wa si ọdọ yin yoo ba dara julọ, ẹ jẹ ki a gbadura ki n le pada wa laisi abawọn—ki n ma baa fi eyi ti o kere julọ ninu otitọ iyinrere pamọ, ki n baa le fi apẹẹrẹ ti o dara lelẹ fun awọn arakunrin mi lati tẹle. Nitori naa, o ṣe e ṣe ki ẹ ma ri oju mi ni Prague mọ; ṣugbọn

bi ifẹ Ọlọrun alagbara julọ yoo ba ṣe e ki n pada si ọdọ yin, ẹ jẹ ki a tẹsiwaju pẹlu ọkan ti o gboya si ninu imọ ati ifẹ ofin Rẹ."

Ninu lẹta miran ti o kọ si alufa ti o di ọmọ ẹyin iyinrere, Huss sọ nipa awọn aṣiṣe ara rẹ pẹlu irẹlẹ ọkan, o ba ara rẹ wi "fun nini ifẹ ninu wiwọ aṣọ olowo iyebiye ati fifi akoko ṣofo ninu awọn iṣẹ ti ko nitumọ." O wa fi awọn igbaniniyanju ti wọn fi ọwọ bani lọkan wọnyi kun: "Ki kíkó ọrọ ati ile jọ o maṣe gba ọkan rẹ kan bikoṣe ogo Ọlọrun ati igbala ọkan awọn eniyan. Ṣọra fun titọju ile rẹ ju ọkan rẹ lọ; ati ju gbogbo rẹ lọ fi iyè si ile ẹmi rẹ. Jẹ onifọkansin ati onirẹlẹ pẹlu awọn alaini, ki o ma siṣe lo awọn ohun ini rẹ lori onjẹ. Bi o ko ba tun igbesi aye rẹ ṣe, ki o si yipada kuro ninu asan, mo bẹru wipe à á bá ọ wi pupọpupọ gẹgẹ bi a ti ṣe si mi. . . . O mọ awọn ikọni mi, nitori ti iwọ ti gba awọn ẹkọ mi lati ọdọmọde rẹ wa; nitori naa mi o nilo lati kọwe si o mọ. Ṣugbọn mo rọ ọ pẹlu aanu Oluwa lati maṣe tẹle apẹẹrẹ mi ninu awọn asan ti o ri ti mo ti ṣubu." O fikun lẹyin apo iwe naa wipe: "Mo rọ ọ, ọrẹ mi lati maṣe ja edidi yii titi iwọ yoo fi ri daju wipe mo ti ku."

Ninu irin ajo rẹ, Huss ri ami itankalẹ awọn ikọni rẹ, o si ri bi awọn eniyan ti fi oju rere wo iṣẹ rẹ. Ọpọ awọn eniyan ni wọn lọ pade rẹ, ninu awọn ilu miran, awọn alaṣẹ ilu sin in kọja laarin ilu wọn.

Nigba ti o de Constance, a fun Huss ni ominira kikun. Yatọ si iwe idaabo ọba, popu funra rẹ tun fi da a loju wipe yoo ri aabo. Ṣugbọn, ni aibikita si awọn ọrọ wọnyi, lẹyin akoko diẹ, pẹlu aṣẹ popu ati ti awọn kadina, a mu Alatunṣe naa, a si ti i mọ inu ọgba ẹwọn ẹlẹgbin. Lẹyin eyi a gbe e lọ si ile iṣọ alagbara kan ti o wa ni ikọja odo Rhine, o si wa nibẹ gẹgẹ bi ẹlẹwọn. Èrè kekere ni popu naa jẹ pẹlu aiṣootẹ rẹ, nitori laipẹ jọjọ a ju oun naa si inu ọgba ẹwọn kan naa. A fi idi rẹ mulẹ niwaju igbimọ wipe o jẹbi awọn iwa ọdaran ti wọn buru julọ, pẹlu ipaniyan, tita awọn ini ijọ, ati agbere, "awọn ẹṣẹ ti ko yẹ ki a daruko." Ohun ti igbimọ naa sọ niyi, a gba ade kuro ni ori rẹ, a si sọ ọ si ọgba ẹwọn. A yọ awọn iyooku ti wọn jijọ n du ipo popu kuro loye pẹlu, a si yan popu miran.

Bi o tilẹ jẹ wipe popu funra rẹ jẹbi awọn iwa ọdaran ti wọn tobi ju eyi ti Huss fi ẹsun rẹ kan awọn alufa lọ, ti o si n beere fun atunṣe nitori wọn, sibẹ ajọ naa ti o yọ popu loye tẹsiwaju lati pa Alatunṣe naa. Itimọle Huss fa ibinu nla ni Bohemia. Awọn ijoye alagbara ṣe atako si iṣekuṣe yii ninu igbimo naa. Ọba, ti inu rẹ ko dun si bi a ko ṣe bọwọ fun iwe idaabobo, tako bi a ṣe fẹ ṣe igbẹjọ rẹ. Ṣugbọn awọn ọta Alatunṣe naa buru, ọkan wọn si ti yigbi. Wọn ṣipẹ si aimọkan, ibẹru, ati itara ọba naa fun ijọ. Wọn sọ idi ti ko fi yẹ "ki a pa adehun mọ pẹlu awọn ẹlẹkọ odi, tabi ẹnikẹni ti a ba funra si wipe o ni ẹkọ odi, bi o ba tilẹ gba iwe idaabobo lati ọdọ ọba." Nitori naa wọn bori.

Aisan ati itimọle ti sọ ọ di alaare,—nitori otutu ati afefe rirun inu ọgba ẹwọn naa jẹ ki o ni iba ti o fere gba ẹmi rẹ—lẹyin-ọrẹyin, a mu Huss wa siwaju igbimọ. Pẹlu ẹwọn ni ara rẹ o duro niwaju ọba, ẹni ti o fi ọwọ ati inu rere ṣe ileri lati daabo bo o. Ni gbogbo akoko gbọọrọ ti a fi ṣe ayẹwo rẹ, o duro gbọin pẹlu otitọ, o si fi tọkantọkan tako awọn aṣiṣe inu ijọ niwaju awọn oloye ijọ ati ti ilu ti wọn pejọ pọ. Nigba ti a beere lọwọ rẹ boya yoo kọ awọn ikọni rẹ silẹ tabi ki o jiya iku, o yan atubọtan ajẹriku.

Oore ọfẹ Ọlọrun fun ni okun. Alaafia ọrun kun inu ọkan rẹ ni aarin awọn ọṣẹ ṣaaju ki a to ṣe idajọ rẹ. O sọ fun ọrẹ rẹ kan wipe, “Mo kọ iwe yii ninu ọgba ẹwọn mi, pẹlu ẹwọn ni ọwọ mi, ti mo si n reti idajọ iku mi ni ọla. . . . Pẹlu iranlọwọ Jesu Kristi, nigba ti a a ba pade ninu alaafia didun ọjọ iwaju, wa a mọ bi Ọlọrun ti fi ara Rẹ han ni alaanu si mi, bi O ṣe ran mi lọwọ to laarin awọn idanwo ati wahala mi.”

O ri iṣẹgun igbagbọ tootọ ninu okunkun ile tubu rẹ. Ninu ala rẹ o pada si ile ijọsin ni Prague, nibi ti o ti waasu iyinrere, o ri popu ati awọn biṣọbu rẹ ti wọn n pa aworan Kristi ti o ya si ara ogiri rẹ. “Iran yii ko iporuuru ọkan ba: ṣugbọn ni ọjọ keji o ri ọpọlọpọ awọn ayaworan ti wọn n tun awọn aworan yii yà si ibi ti o pọ si, ati pẹlu awọn ọda to han ketekete si. Nigba ti wọn pari iṣẹ wọn tan, awọn ayaworan naa ti ọpọ awọn eniyan rọgba yi ka sọ wipe, ‘Ẹ jẹ ki awọn popu ati awọn biṣọbu wa nisinsinyii; wọn ki yoo si le pa wọn rẹ mọ!’” Bi o ti n rọ ala rẹ, Alatunṣe naa sọ wipe: “Eyi damiloju wipe a ki yoo le pa aworan Kristi rẹ laelae. Wọn fẹ lati pa a run, ṣugbọn awọn oniwaasu ti wọn dara ju mi lọ yoo tun-un kun ni ọkan awọn eniyan.”

A mu Huss wa siwaju igbimọ fun igba ikẹyin. Ọpọ awọn eniyan ati awọn ẹni nla ni wọn wa nibe—ọba, awọn ijoye ijọba naa, awọn iranṣẹ ọba, awọn kadina, biṣọbu, ati awọn alufa, ati ọgọọrọ awọn eniyan ti wọn wa lati wo iṣẹlẹ ọjọ naa. Lati gbogbo ibi ti a ti n ṣe ẹsin Kristẹni ni awọn eniyan ti wa lati wa jẹri si irubọ nla akọkọ ninu ijakadi ọlọjọ gbọọrọ ti yoo funni ni ominira ẹri ọkan yii.

Nigba ti a pe e fun ipinu ikẹyin rẹ, Huss sọ wipe oun kọ lati yi ohùn pada, nigba ti o tẹju mọ ọba ti a fi ainitiju kọ ileri ti o ṣe silẹ, o sọ wipe: “Mo pinu lati inu ọkan mi wa lati fi ara han niwaju igbimọ yii, labẹ idaabobo ati ootọ inu ọba ti o wa nibi.” Oju Sigismund pọn bi gbogbo awọn ti wọn wa ninu igbimọ naa ti yi oju si ọdọ rẹ.

Nigba ti a ṣe idajọ rẹ tan, a bẹrẹ ètò ifinisẹsin. Awọn biṣọbu wọ ẹlẹwọn wọn ni aṣọ ni bi a ti n wọ awọn alufa ni aṣọ, bi o ti n wọ aṣọ alufa, o sọ pe: “A wọ Jesu Kristi Oluwa wa ni aṣọ funfun, nigba ti Hẹrodu ran An lọ si ọdọ Pilatu gẹgẹ bi ọna lati tabuku Rẹ.” Ni igba ti a tun gba a niyanju ki o yi ọrọ rẹ pada, o yi oju pada si awọn eniyan,

o dahun wipe: “Iru oju wo ni maa wa fi wo ọrun? Bawo ni maa ṣe wo ọgọọrọ awọn eniyan ti mo ti waasu iyinrere alailabawọn fun? Rara; igbala wọn niyelori loju mi ju ara otoṣi ti a yan fun iku yii lọ.” A wa bọ awọn ewu naa nikọọkan, olukuluku awọn bịṣọbu si n fi gegun bi wọn ti n ṣe ipa ti wọn. Nikẹyin, “wọn fi ade alufa ti a fi pepa ṣe, ti a ya awọn ẹmi eṣu si lara lọna ti o banilẹru, de e lori; a kọ ‘Olori awọn asọrọ odi’ si niwaju lọna to han gedegbe. Huss sọ wipe, tayọtayọ ni maa fi de ade itiju nitori Rẹ Jesu, ẹni ti o de ade ẹgun nitori mi.’”

Nigba ti a ṣe eyi tan, “awọn alufa sọ wipe, ‘Nisinsinyii, a fi ọkan rẹ le eṣu lọwọ.’ John Huss, ni gbigbe oju rẹ si oke ọrun, sọ wipe, ‘Emi fi ẹmi mi si ọwọ Rẹ, Jesu Oluwa, nitori pe O ti gbamila.’”

A wa file awọn alaṣẹ ilu lọwọ, wọn si mu u lọ si ibi ti a o ti pa a. Ọpọlọpọ awọn eniyan ni wọn to lọwọọwọ lọ sibẹ, awọn jagunjagun, awọn alufa ati awọn bịṣọbu ninu aṣọ igunwa wọn, ati awọn ti n gbe ni ilu Constance. Nigba ti a de e mọ òpó, ti o ku ki a da ina si lara, a tun rọ ajẹriku naa lati gba ara rẹ la nipa kikọ awọn aṣiṣe rẹ silẹ. Huss dahun pe, “Iru aṣiṣe wo ni maa kọ silẹ? Emi ko jẹbi ohunkohun. Mo fi Ọlọrun ṣe ẹlẹri wipe ohun gbogbo ti mo kọ silẹ ti mo si waasu rẹ jẹ pẹlu erongba lati gba awọn ọkan la kuro ninu ẹṣẹ ati iparun; nitori naa mo fi tayọtayọ fi idi ohun gbogbo ti mo kọ silẹ ti mo si waasu rẹ mulẹ pẹlu ẹjẹ mi.” Nigba ti ina n jo yii ka, o bẹrẹ si ni kọrin pe, “Jesu Iwọ Ọmọ Dafidi, ṣaanu fun mi,” bi o ṣe kọrin niyi titi ti ohùn rẹ fi dakẹ titi lae.

Iduro akọni rẹ ya awọn ọta rẹ paapa lẹnu. Onifọkansin atẹle popu sọ nipa ijẹriku Huss, ati ti Jerome ẹni ti o ku laipẹ rẹ bayi wipe: “Awọn mejeeji ṣe ọkan wọn giri nigba ti wakati ikẹyin wọn de. Wọn mura silẹ fun ina afi bi ẹni ti n lọ si ibi ase igbeyawo. Wọn kò kigbe oró. Nigba ti ina n jo, wọn bẹrẹ si i kọ orin; pẹlu agbara ni ina ti n jo fi dawọ orin wọn duro.”

Nigba ti ara Huss jo tan, a ko eeru rẹ, pẹlu erupẹ ti o jo le lori, a si da wọn sinu odo Rhine, ti o gbe lọ sinu agbami okun. Awọn oninunibini rẹ ro ninu asan wọn wipe wọn ti fa otitọ ti o waasu rẹ tu. Ko ye wọn daradara wipe eeru ti omi gbe lọ fọn lọ si gbogbo orilẹ ede aye; wipe ni ilẹ ti a koi tii mọ yoo so eso pupọ ni ijẹri si otitọ. Ohùn ti o fọ ninu gbọngan igbimọ ni Constance yoo ró ni gbogbo akoko ti n bọ. Huss kò sí mọ, ṣugbọn awọn otitọ ti o ku nitori rẹ ko le parun mọ lae. Apẹẹrẹ igbagbọ ati iduroṣinṣin rẹ yoo fun ọpọ awọn eniyan lokun lati duro ṣinṣin fun otitọ loju ijiya ati iku. Bi a ṣe pa fi iwa ika ati imọọmọ ṣẹtan Romu han gbogbo aye. Bi o tilẹ jẹ wipe awọn ọta otitọ ko mọ, wọn n ran iṣẹ otitọ lọwọ, eyi ti wọn n ṣiṣẹ lasan lati parun.

Amọ a yoo tun gbe igi idanasuni miran ro ni Constance. Ẹjẹ ajẹri otitọ miran yoo jẹri si otitọ. Nigba ti Jerome n ki Huss pe o digboṣe

nigba ti o n lọ si igbimọ, o gba a niyanju lati duro ṣinṣin ki o si ni igboya, o tun sọ wipe, bi o ba bọ sinu wahala kankan, oun funra oun yoo wa ran an lọwọ. Nigba ti o gbọ wipe a sọ Alatunṣe naa si atimọle, ọmọleyin tootọ yii mura kankan lati mu ileri rẹ ṣẹ. Laisi iwe idaabobo oun ati olubakọwọrin kan lọ si Constance. Nigba ti o debẹ, o ri mọ wipe oun tilẹ fi ẹmi ara oun wewu ni, laisi anfani lati ṣe ohunkohun lati gba Huss silẹ. O sa kuro ni ilu naa, ṣugbọn a fi ipa mu nigba ti o n pada si ile, a da pada, a fi ẹwọn de e, a si fi si ikawọ awọn ẹgbẹgun kan. Nigba ti a kọkọ mu wa siwaju igbimọ, ariwo "Ẹ sun nina! ẹ sun nina!" ni a fi bo akitiyan rẹ lati dahun si gbogbo ẹsun ti a fi kan an mọlẹ. A ju u sinu ọgba ẹwọn, a de e ni ọna ti yoo gba ni i lara, a si n fun ni burẹdi ati omi. Leyin oṣu diẹ inira itimọle rẹ fẹ gba ẹmi rẹ, nitori ti awọn ọta rẹ bẹru ki o ma baa bọ kuro ni ọwọ wọn, wọn ko fi iya pupo jẹ mọ, bi o tilẹ jẹ wipe o wa ninu ọgba ẹwọn fun ọdun kan.

Iku Huss ko yori si ohun ti awọn atẹle popu lero. Bi wọn ti tapa si iwe idaabobo rẹ fa wahala ibinu nla, nitori naa, gẹgẹ bi ohun ti o rọrun diẹ si, igbimọ naa pinnu, bi o ba ṣe e ṣe lati fi ipa mu Jerome lati yi igbagbọ rẹ pada, dipo ki wọn o sun un nina. A mu wa siwaju igbimọ, a wa fi lọ ọ boya yoo yi igbagbọ rẹ pada, tabi ki a pa nipa sisun nina. I ba jasi aanu bi o ba ti ku ni ibẹrẹ itimọle rẹ bi a ba fi we ijiya nla ti o ti o ti jẹ; ṣugbọn nisisinyii, aisan, inira inu ọgba ẹwọn, ati ijiya iporuuru ọkan ati ireti ohun ti o n bọ ti sọ di alailera; ko si awọn ọrẹ rẹ ni ọdọ rẹ, iku ọrẹ rẹ Huss si ba a ninu jẹ, awọn nnkan wọnyi ko irẹwẹsi ba, o si gba lati ṣe ifẹ igbimọ. O jẹjẹ lati duro ninu igbagbọ ijọ Katoliki, o si gba ipinu igbimọ ni bi wọn ti bu ẹnu atẹ lu awọn ikọni Wycliffe ati ti Huss, ayafi awọn "otitọ mimọ" ti wọn kọni.

Nipa ọgbọn ẹwẹ rẹ, Jerome gbero lati pa ẹri ọkan rẹ lẹnu mọ, ki o si bọ kuro ninu iparun rẹ. Ṣugbọn nigba ti o danikan wa ninu tubu, o ri ohun ti o ṣe kedere. O ro nipa igboya ati iṣotitọ Huss, o wa fi we bi oun ti sẹ otitọ. O ro nipa Oluwa ọrun Ẹni ti o ti ṣe ileri lati sin, ti o titori rẹ fi ara da iku agbelebu. Ṣaaju ki o to kọ igbagbọ rẹ silẹ, o ri itunu ninu idaniloju ojurere Ọlọrun laarin gbogbo ijiya rẹ; ṣugbọn nisinsinyii, iyemeji ati ikẹdun ni o n jẹ ọkan rẹ niya. O mọ wipe oun yoo tun ṣe ikọsilẹ awọn nnkan miran ki oun to le wa ni alaafia pẹlu Romu. Ifasẹyin patapata ni ọna ti o n rin yii yoo yọri si. O ṣe ipinu ọkan rẹ: Ko ni sẹ Oluwa re lati le bọyọ kuro ninu ijiya ranpẹ.

Laipẹ, a tun da pada wa siwaju igbimọ. Ohun ti o sọ ko tẹ awọn adajọ rẹ lọrun. Iku Huss ti ta oungbe wọn fun ẹjẹ ji, wọn wa n beere fun ẹran tuntun. Nipa kikọ otitọ silẹ patapata nikan ni Jerome fi le da ẹmi rẹ si. Ṣugbọn o ti pinu lati fi idi igbagbọ rẹ mulẹ, ati lati tẹle ajẹriku arakunrin rẹ lọ sinu ina.

O sọ wipe oun ko kọ igbagbọ oun silẹ mọ, ati bi ẹni ti o n ku lọ, o beere fun anfani lati wi awijare oun. Nitori pe wọn bẹru agbara ọrọ rẹ, awọn alufa ṣe e ni dandan wipe ki o kan fi idi otitọ awọn ẹsun ti wọn fi kan an mulẹ lasan ni tabi ki o sẹ wọn. Jerome ko faramọ iru iwa ika ati ifiyajẹni yii. O sọ pe, "Fun ọta-din-nirinwo ọjọ ni ẹ fi ti mi mọ ọgba ẹwọn buruku yii, laarin idọti, irira, oorun, ati aini fun ohun gbogbo; ẹ wa mu mi wa siwaju yin, mo tẹti mi silẹ lati gbọ ti awọn ọta kikoro mi, ẹ wa kọ lati gbọ temi. . . . Bi ẹ ba jẹ ọlọgbọn eniyan nitootọ, ati imọlẹ aye, ẹ ṣọra ki ẹ ma ba a ṣẹ si otitọ. Bi o ba jẹ ti emi ni, ẹlẹran ara alailagbara ni mi; ẹmi mi ko ṣe pataki pupọ; nigba ti mo sọ fun yin lati maṣe ṣe idajọ èké, mi o sọrọ nitori ara mi bikoṣe nitori yin"

Lẹyin-ọrẹyin, a gba a laaye. Jerome kunlẹ niwaju awọn adajọ rẹ, o si gbadura ki Ẹmi ọrun o dari ero ati ọrọ oun, ki o ma ba a sọ ohunkohun ti o yatọ si otitọ tabi ti ko yẹ Oluwa rẹ. Ni ọjọ naa ni ileri Oluwa fun awọn ọmọ ẹyin Rẹ wa si imuṣẹ fun: "A yoo mu yin wa siwaju awọn alaṣẹ ati ọba nitori Mi. . . . Ṣugbọn nigba ti a ba fi yin le wọn lọwọ, ẹ maṣe ṣe aniyan nitori ohun ti ẹyin yoo wi tabi bi ẹyin yoo ti sọrọ: nitori ni wakati naa ni a o fun yin ni ohun ti ẹyin yoo wi. Nitori ki i ṣe ẹyin ni o n sọrọ, bikoṣe Ẹmi Baba yin ni o n soro ninu yin." Matiu 10:18—20.

Ani ẹnu ya awọn ọta Jerome, ọrọ rẹ si jọ wọn loju. Fun odindi ọdun kan ni o ti wa ninu ọgba ẹwọn, ti ko le kawe tabi riran, ti o n jiya ti ara ati iporuuru ọkan. Sibẹ, ọrọ rẹ yeni yekeyeke, o si lagbara a fi bi ẹnipe o n kẹkọ laisi idiwọ. O tọka awọn olugbọ rẹ si ọpọ awọn eniyan mimọ ti awọn adajọ alaiṣootọ da lẹbi. Ni gbogbo igba a maa n ri awọn ti a maa n kẹgan ti a si n ṣaata, bi o tilẹ jẹ wipe wọn n ṣe akitiyan lati yọ ori awọn eniyan akoko wọn sókè; ṣugbọn nikẹyin a maa n ri wipe wọn yẹ fun iyin. Igbimọ alailootọ da Kristi funra Rẹ lẹbi gẹgẹ bi onisẹ ibi.

Nigba ti o n kọ igbagbọ rẹ silẹ, Jerome fi ọwọ si otitọ idajọ ti o da Huss lebi; o wa sọ wipe oun ti ronupiwada, o si jẹri si iwa ailẹṣẹ ati iwa mimọ ajeriku naa. O sọ pe, "Mo mọ ọ lati igba ọdọmọde rẹ wa." "O jẹ eniyan rere, oniwa otitọ, ati oniwa mimọ; a da a lẹbi bi o tilẹ jẹ wipe o wa lailẹṣẹ. . . . Emi pẹlu—ani emi ṣetan lati ku: emi ko ni sa fun ijiya ti awọn ẹlẹri èké ati awọn ọta mi pese silẹ fun mi, awọn ti yoo jiyin aiṣododo wọn niwaju Ọlọrun nla Ẹni ti ohunkohun ko le tanjẹ."

Ni dida ara rẹ lẹbi pẹlu bi o ti sẹ otitọ, Jerome tẹsiwaju: "Ninu gbogbo awọn ẹṣẹ ti mo ti ṣẹ lati igba èwe mi wa, ko si eyi ti o wuwo ni ọkan mi ti o si bami lọkan jẹ bi eyi ti mo ṣẹ ninu ile buburu yii, nigba ti mo fara mọ idajọ ẹṣẹ ti a ṣe fun Wyclffe, ati si ajẹriku mimọ, John Huss, ọga mi ati ọrẹ mi. Bẹẹ ni! Mo jẹwọ rẹ lati inu ọkan mi, mo tun

sọ wipe, mo wariri pẹlu itiju, nigba ti mo kọ awọn ikọni wọn silẹ nitori ibẹru iku. Nitori naa, mo bẹ . . . Ọlọrun Alagbara lati fi aanu dari awọn ẹṣẹ mi ji mi, ati eyi ni pataki julọ, eyi ti o buru julọ ninu wọn." O na ika si awọn onidajọ, o wa sọ pẹlu igboya wipe: "Ẹ da Wycliffe ati John Huss lẹbi, ki i ṣe nitori pe wọn yi awọn ikọni ijọ pada, ṣugbọn nitori pe wọn ba iwa ibajẹ ti awọn alufa n wu wi—ìwúga wọn, igberaga wọn, ati gbogbo iwa ọdaran awọn alufa ati adari ijọ. Awọn ohun ti wọn sọ, ti ẹ ko le yipada, ohun naa ni emi ro ti mo si sọ bii ti wọn."

Wọn da ọrọ rẹ duro. Awọn alufa agba wariri pẹlu ibinu, wọn kigbe wipe: "Ẹri wo ni a tun n wa? A ti fi oju ara wa ri ẹlẹkọ odi ti o yigbi julọ!"

Laimira nitori awọn ariwo wọnyi, Jerome sọ wipe: "Kini! ṣe ẹ ro wipe mo bẹru lati ku ni? Ẹ fi mi sinu ọgba ẹwọn buburu yii fun odindi ọdun kan, ohun ti o buru ju iku funra rẹ lọ. Iwa ika ti ẹ wu si mi ju eyi ti ẹ le wu si musulumi, Ju tabi abọrisa lọ, ti ẹran ara mi ti fẹrẹ jẹ kuro lara egungun mi laaye; sibẹ mi o ṣe awawi, nitori awawi ko yẹ ẹni ti ẹmi ati ọkan rẹ ba ṣe giri; ṣugbọn emi ko le sọ bi iyalẹnu mi si iru iwa buburu nla ti a wu si Kristẹni yii ti pọ to."

Iji ibinu tun tu jade, a si yara da Jerome pada sinu ọgba ẹwọn. Sibẹ awọn kan wa ninu igbimọ naa ti ọrọ rẹ wọ lọkan pupọpupọ, ti wọn si fẹ lati gba ẹmi rẹ la. Awọn ijoye ijọ bẹ ẹ wo wọn si rọ ọ lati gba ipinu igbimọ naa. A gbe awọn ohun ti o dara kalẹ siwaju rẹ gẹgẹ bi ẹbun bi o ba le yipada kuro ninu atako rẹ si Romu. Ṣugbọn Jerome duro gbọin bi i ti Oluwa rẹ nigba ti a fi ogo aye yii lọ Ọ.

O sọ wipe, "Ẹ fi han mi lati inu Iwe Mimọ ibi ti mo ti ṣe aṣiṣe, emi yoo si kọ ọ silẹ."

Ọkan ninu awọn ti n dan wo sọ wipe, "Iwe Mimọ! ṣe ohun gbogbo ni ki a maa fi dán wo ni? Tani o le ni òye wọn ayafi bi ijọ ba ṣe itumọ wọn?"

Jerome dahun wipe, "Ṣe ẹkọ eniyan wa yẹ lati gbagbọ ju iyinrere Olugbala wa lọ ni?" "Pọlu ko gba awọn ti o kọwe si niyanju lati tẹti si ẹkọ eniyan, ṣugbọn o sọ pe, 'Ẹ wa Iwe Mimọ.'"

"Ẹlẹkọ odi! O dun mi wipe mo bẹbẹ pẹlu rẹ fun igba ti o pẹ bayi," ni a fi da lohun. "Mo ri wipe eṣu ni o n ti ọ leyin."

Laipẹ jọjọ, a ṣe idajọ idalẹbi fun. A mu lọ si ibi kan naa ti Huss ti padanu ẹmi rẹ. O n kọrin bi o ti n lọ, oju rẹ mọlẹ pẹlu ayọ ati alaafia. O tẹ oju mọ Kristi, iku ko si ba a lẹru mọ. Nigba ti ẹni ti yoo pa fẹ tan ina si igi naa, o duro si ẹgbẹ rẹ, ajẹriku naa sọ wipe: "Fi igboya wa siwaju; tan ina naa ni iṣoju mi. Bi ẹru ba n ba mi ni, n ki ba ti wa nibi."

Adura ni awọn ọrọ ti o sọ kẹyin bi ina ti n ru bo o mọlẹ. O kigbe, "Oluwa Baba Alagbara, ṣaanu fun mi, ki o si dari awọn ẹṣẹ mi ji mi; nitori pe Iwọ mọ wipe mo fẹran otitọ Rẹ." Ohùn rẹ dakẹ, ṣugbọn ètè

rẹ si n mi ninu adura. Nigba ti ina ṣe iṣẹ rẹ tan, a ko eeru ajẹriku naa, ati ilẹ ibi ti o jo si, bii ti Huss, a da a sinu odo Rhine.

Bayi ni awọn olotitọ Ọlọrun ti n tan imọlẹ ṣe ku. Ṣugbọn imọlẹ otitọ ti wọn n polongo—imọlẹ apẹẹrẹ akọni wọn—ni a ko le paku. Bi awọn eniyan ba ti ṣe le ṣe aṣeyọri to lati di oorun lọwọ ninu iṣẹ rẹ, bẹẹ naa ni wọn ṣe le ṣe aṣeyọri lati di ọjọ ti n yọ si ori aye lọwọ.

Bi a ti ṣe pa Huss tan ina ibinu ati ibẹru ni Bohemia. Gbogbo orilẹ ede naa ni wọn mọ wipe n ṣe ni o ṣubu si ọwọ arankan awọn alufa ati ẹtan ọba. A sọ wipe o jẹ ẹni ti n fi tọkantọkan kọni ni otitọ, wọn si sọ wipe igbimọ ti o dajọ iku fun jẹbi ẹsun ipaniyan. Awọn eniyan wa n fiye si ikọni re ju ti atẹyinwa lọ. Popu ti paṣe ki a sun awọn iwe Wycliffe nina. A wa ko awọn ti a ko parun sita lati inu ibi ti a ko wọn pamọ si, a si n kọ wọn ni ibamu pẹlu Bibeli, tabi eyikeyi ti awọn eniyan ba le ri, ọpọlọpọ ninu wọn si ti ipa eyi gba igbagbọ ti a tunṣe.

Awọn ti wọn pa Huss ko kawọ gbinra lati maa wo ki otitọ o bori. Popu ati ọba parapọ lati pa ẹgbẹ naa run, wọn si dari awọn ọmọ ogun Sigismund wa si Bohemia.

Ṣugbọn a gbe oludande kan dide. Ziska, ẹni ti oju rẹ fọ patapata laipẹ ti wọn bẹrẹ ogun, sibẹ ti o jẹ ọkan ninu awọn adari ogun ti wọn muna doko julọ ni akoko rẹ, ni olori awọn ara Bohemia. Wọn gbẹkẹle iranlọwọ Ọlọrun ati ododo ohun ti wọn n ja fun, awọn eniyan wọnyi doju ija kọ ẹgbẹgun ti o lagbara julọ ti a le ko wa ba wọn jagun. Lati igba de igba ni ọba n ko awọn ẹgbẹgun tuntun jọ, ti o si n kọlu Bohemia, ṣugbọn pẹlu itiju ni a fi maa n le wọn pada. Awọn atẹle Huss ni igboya kọja ibẹru iku, kò sì sí ohun ti o le doju kọ wọn. Lẹyin ọdun diẹ ti a bẹrẹ ogun yii, Ziska onigboya ku; ṣugbọn Procopius, ẹni ti o ni igboya ti o si ni ọgbọn bii tire, ti o tun jẹ adari ti o dara ju u lọ ninu awọn ibomiran, ni o gba ipo rẹ.

Nigba ti awọn ọta Bohemia mọ wipe jagunjagun afọju ni ti ku, wọn ri gẹgẹ bi anfani ti o dara lati ri ohun gbogbo ti wọn ti padanu gba pada. Popu wa kede ogun ẹsin si awọn atẹle Huss, bi i ti tẹle, ẹgbẹgun nla tun dó ti Bohemia, ṣugbọn ibaku nla ni wọn tun ri. A tun pe ogun ẹsin miran. A ko awọn eniyan, owó, ati ohun ija ogun jọ lati gbogbo orilẹ ede ti wọn ti n ṣe ẹsin ijọ padi ni Europe. Ọgọọrọ awọn eniyan ni wọn lọ si abẹ asia ijọ paadi, ọkan wọn balẹ wipe nikẹyin, wọn yoo fi opin si awọn ẹlẹkọ odi atẹle Huss. Pẹlu idaniloju iṣẹgun, ẹgbẹgun nla yii wa si Bohemia. Awọn eniyan naa ko ara wọn jọ pọ lati le wọn sa. Awọn ẹgbẹgun mejeeji n sunmọ ara wọn titi ti o fi jẹ wipe odo kan ni o la wọn. “Awọn ologun ẹsin ni wọn pọ ju ni iye, ṣugbọn dipo ki wọn rọ wọ inu odo naa, ki wọn si wọya ija pẹlu awọn atẹle Huss ti wọn ti ọna jijin wa baja, n ṣe ni wọn duro ti wọn n wo awọn

jagunjagun wọnyi ni idakẹrọrọ.” Lojiji, ipaya nla bọ lu ẹgbẹgun naa. Laiṣe ikọlu kankan, ẹgbẹ nla naa fọ, wọn si tuka afi bi ẹnipe agbara airi ni o tu wọn ka. Awọn ẹgbẹgun atẹle Huss pa wọn lẹgbẹlẹgbẹ, wọn si n le awọn ti wọn sa kuro ni oju ogun lọ, ọpọ ikogun ni o bọ si ọwọ awọn aṣẹgun, ti o fi jẹ wipe, dipo ki ogun naa o sọ wọn di otoṣi, n ṣe ni o sọ awọn Bohemia di ọlọrọ.

Ni ọdun diẹ si, labẹ popu miran, a tun bẹrẹ ogun ẹsin miran. Bii ti tẹlẹ, a ko awọn eniyan ati ohun èlò jọ lati gbogbo orilẹ ede ti n ṣe ẹsin ijọ paadi ni Europe. Ileri nla ni a ṣe fun awọn ti yoo ba kopa ninu iṣẹ ti o lewu yii. A ṣe ileri idariji ẹṣẹ ni kikun fun ẹṣẹ ti o ba buru julọ fun gbogbo awọn onija ẹsin. A ṣe ileri ẹbun nla ni ọrun fun gbogbo awọn ti wọn ba ku si ogun, awọn ti wọn ba si ye a gba ọla ati ọrọ ti wọn ba ri loju ogun. A tun ko ẹgbẹgun nla jọ, wọn tun wọ ibodè Bohemia. Awọn ẹgbẹgun atẹle Huss rọra sa pada niwaju wọn, nipa eyi wọn n tan wọn wa si ibi ti o tẹju, ti eyi si jẹ ki wọn o maa ka iṣẹgun ti wọn ti ri na. Nikẹyin ẹgbẹgun Procopius duro, wọn yiju si awọn ọta wọn, wọn tẹsiwaju lati doju ija kọ wọn. Awọn jagunjagun ẹsin wa ri aṣiṣe wọn, wọn duro si ibi agọ wọn, wọn n reti ikọlu. Bi wọn ti gbọ iro ẹgbẹgun ti n bọ, ani ki wọn to ri awọn atẹle Huss, ibẹru bo awọn jagunjagun ẹsin. Awọn ijoye, awọn adari ogun ati awọn ọmọ ogun lasan, sọ ihamọra wọn danu, wọn si tuka si ibikibi ti wọn ba le sa si. Lasan ni aṣoju popu, ti o jẹ adari ogun naa, ṣe lati ko awọn ẹgbẹgun rẹ ti ẹru ba ti wọn si ti tuka jọ. Pẹlu gbogbo wahala rẹ, oun pẹlu sa lọ pẹlu awọn ti wọn sa kuro ni oju ogun. A le wọn patapata, bii ti tẹlẹ, ikogun nla tun bọ si ọwọ awọn aṣẹgun.

Bayii ni igba keji, ẹgbẹgun nla ti awọn orilẹ ede ti wọn lagbara julọ ni Europe ran jade, awọn onigboya, ti wọn fẹran ogun, ti a kọ, ti a si pese silẹ fun ogun, sá laisi ikọlu niwaju awọn ti wọn n gbeja orilẹ ede kekere ti ko lagbara. Eyi jẹ ifihan agbara Ọlọrun. Ẹru lati ọrun wa ni o kọlu awọn ti n gbe ija koni yii. Ẹni ti o bi ẹgbẹgun Farao ṣubu sinu Okun Pupa, ti o le awọn ẹgbẹgun Midiani sá kuro niwaju Gidioni ati ọgọrun mẹta eniyan rẹ, ti o bi ẹgbẹgun awọn Asiria onigberaga wó ni aṣalẹ kan ṣoṣo, ni O tun na ọwọ Rẹ lati sẹ agbara aninilara rọ. “Wọn wa ninu ibẹru nla nibi ti ẹru ko si: nitori Ọlọrun ti fọn egungun ẹni ti o dó ti ọ ka: iwọ tì wọn loju nitori Ọlọrun ti ta wọn nu.” O. Dafidi 53:5.

Nigba ti awọn adari ijọ aguda ri wipe wọn ko le ṣẹgun pẹlu ipa, wọn wa lo ọgbọn ẹwẹ. Wọn ṣe adehun pẹlu wọn, eyi ti o tan wọn si ọwọ agbara Romu, nigba ti o n fi ara han bi ẹnipe o n fun awọn ara Bohemia ni ominira ẹri ọkan. Awọn ara Bohemia sọ ohun mẹrin ti

o le jẹ ki wọn wa ni alaafia pẹlu Romu: wiwaasu Bibeli laisi idiwọ, ki gbogbo ijọ o ni ẹtọ si akara ati waini ara Oluwa, ati lilo ede abinibi wọn ninu ijọsin; yiyọ awọn alufa kuro ninu gbogbo ipo ati ibi aṣẹ ilu; ati nigba ti iwa ọdaran ba ṣẹlẹ, ki ile ẹjọ o ni aṣẹ lori alufa ati ọmọ ijọ bakan naa. Nikẹyin, awọn alaṣẹ ijo paadi "fi ohùn ṣọkan lati gba awọn ohun ti awọn atẹle Huss n wi, ṣugbọn igbimọ—eyi i ni ọba ati popu—ni yoo ni ẹtọ lati ṣe alaye wọn, lati ṣe eyi tumọ si wipe awọn ni wọn a le sọ ohun ti o n wi gan an." Wọn wa ṣe iwe adehun lori awọn nnkan wọnyi, ohun ti Romu ko le gba pẹlu ipa, o wa ri gba pẹlu ẹtan ati ayinike; nitori nipa ṣiṣe itumọ ifẹ awọn atẹle Huss gẹgẹ bi o ti ṣe si Bibeli, o le yi itumọ wọn pada fun anfani ara rẹ.

Ọpọlọpọ awọn ara Bohemia ri wipe o tako ominira wọn, wọn kò si fi ọwọ si iwe naa. Ija ati iyapa wa bẹrẹ, eyi ti o fa rogbodiyan ati itajẹsilẹ laarin wọn. Ninu wahala yii ni Procopius kú si, ti ominira awọn ara Bohemia si bọ sọnu.

Sigismund, ẹni ti o fi Huss ati Jerome han wa di ọba Bohemia, bi o tilẹ jẹ wipe o jẹjẹ lati daabobo ẹtọ awọn ara Bohemia, o tẹsiwaju lati fi idi ẹsin popu mulẹ. Ṣugbọn èrè perete ni o ri pẹlu bi o ti ṣe ṣe igbọran si Romu. Ogún ọdun ninu gbesi aye rẹ kun fun wahala ati idamu. Awọn ọmọ ogun rẹ ṣofo, bẹẹ si ni ọrọ rẹ jo tan lori ogun ọlọjọ gbọọrọ ti ko mu èrè wá; lẹyin ti o ṣe akoso fun ọdun kan o ku, o fi ijọba rẹ silẹ ni bèbè ogun abẹle, o si fi orukọ ti a kó ẹgan bá silẹ fun awọn ọmọ rẹ.

Rukerudo, ija, ati itajẹsilẹ n tẹsiwaju, awọn ẹgbẹgun ilẹ ajeji tun wa ko ogun ja Bohemia, bẹẹ si ni ija abẹle n ba orilẹ ede naa finra. A si ṣe inunibini kikan si awọn ti wọn si jẹ olootọ si iyinrere.

Bi ti awọn ara wọn iṣaaju, nipa ṣiṣe adehun pẹlu Romu, wọn gba awọn aṣiṣe rẹ, awọn ti wọn si jẹ olootọ si igbagbọ igba atijọ parapọ di ijọ miran, wọn pe orukọ ara wọn ni "United Brethren." Gbogbo awọn eniyan ni wọn sọ ọrọ buburu si wọn nitori eyi. Sibẹ wọn si duro ṣinṣin. O di dandan fun wọn lati wa aabo ninu igbó ati ihò ilẹ, sibẹ wọn si n pejọ pọ lati ka ọrọ Ọlọrun ati lati jumọ pọ jọsin Rẹ.

Nipasẹ awọn iranṣẹ ti a ran jade lọ si awọn orilẹ ede miran ni bonkẹlẹ, wọn mọ wipe nihin, lọhun, "awọn atẹle otitọ ti wọn farasin wa, diẹ ni ilu yii, diẹ ni ilu ọhun, ti a n ṣe inunibini si bii ti wọn; ati pe ijọ atijọ wa ni aarin awọn oke Alps, ti o duro lori ipilẹ Iwe Mimọ, ti o si n tako awọn iwa ibajẹ ẹsin ibọrisa Romu." Wọn gba imọ yii pẹlu ayọ nla, wọn si bẹrẹ ifọrọwerọ pẹlu awọn Kristẹni Waldenses.

Pẹlu iduroṣinṣin si iyinrere, awọn ara Bohemia la aṣalẹ inunibini kọja, ninu okunkun ti o dudu julọ, wọn n ṣọna bi awọn ti wọn n wọna fun owuro. "A ṣe ipinu lori wọn ni ọjọ buburu, ṣugbọn . .

. wọn ranti awọn ọrọ ti Huss kọkọ sọ, ti Jerome tun tun sọ, wipe ọgọrun ọdun yoo kọja ki oju o to mọ. Eyi dabi ọrọ ti Josẹfu sọ fun awọn ẹya ti wọn wa ni igbekun wipe: ‘Mo n ku lọ, Ọlọrun yoo si bẹ yin wo ni tootọ, yoo si mu yin jade,’ ni eti awọn ara Tabori [awọn atẹle Huss]. “Opin ọrundun karundinlogun ri bí awọn ijọ Ara ti n pọ si bi o tilẹ jẹ wipe ko yara kankan. Lootọ a n fi iya jẹ wọn, ṣugbọn wọn ni isinmi diẹ. Ni ibẹrẹ ọrundun kẹrindinlogun, ijọ wọn ti to igba (200) ni Bohemia ati Moravia.” “Bayi ni awọn aṣẹku ti wọn sa asala kuro ninu ibinu apanirun ti ida ati ina ṣe ṣe ori ire lati ri bi ọjọ ti Huss sọ tẹlẹ ṣe n yọ.”

7

Ìyapa Luther Kúrò Ni Romu

Martin Luther ṣe pataki julọ laarin awọn ti a pe lati dari ijọ kuro ninu okunkun ẹsin popu wa si inu imọlẹ igbagbọ mimọ. Onitara, ti o ni ifẹ ọkan, ati olufọkansin, ti ko mọ ibẹru kankan ayafi ibẹru Ọlọrun, ti ko si mọ ipilẹ kankan fun igbagbọ ẹsin ayafi Iwe Mimọ, Luther ni ẹni ti o yẹ fun akoko rẹ; Ọlọrun ṣe iṣẹ nla fun atunṣe ijọ ati ilalọyẹ araye nipasẹ rẹ.

Bii awọn ti wọn kọkọ kede iyinrere, Luther jẹ talaka eniyan. Ile agbẹ aroko ara Germany kan ni o ti lo ibẹrẹ igbesi aye rẹ. Nipa iṣẹ ojumọ gẹgẹ bi awakuṣa ni baba rẹ fi ri owo ẹkọ rẹ san. O fẹ ki o di agbẹjọro; ṣugbọn Ọlọrun fẹ lati fi ṣe onkọle ninu tẹmpili nla ti o rọra n ga soke lati ọdun pupọ seyin wa. Wahala, aini ati ikora-ẹni-nijanu ni ọna ti o lagbara ni ile ẹkọ ti Ọlọrun pese silẹ fun Luther fun iṣẹ ti o ṣe pataki ninu igbesi aye rẹ.

Baba Luther jẹ ọlọpọlọ pipe ti iyè rẹ ja fafa, o ni okun iwa, ki i yẹ kuro ninu ipinu rẹ, o jẹ olootọ, onipinu, ati oninukan. O jẹ olootọ si ohun ti o ba gbà wipe o jẹ ojuṣe rẹ laika ohun ti yoo ba ti ẹyin rẹ wa si. Iṣọwọ ronu rẹ ti o peye mu ki o fi oju ti ko tọ wo ilana ìdéra ẹni mọ inu ile ẹsin. Inu rẹ bajẹ pupọpupọ nigba ti Luther wọ inu ile ẹsin laiṣe wipe o fi ọwọ si; lẹyin ọdun meji ni o to ba ọmọ rẹ laja, ṣugbọn eyi ko yi ero rẹ pada.

Awọn obi Luther mu ẹkọ ati itọsọna awọn ọmọ wọn ni ọkunkundun. Wọn ṣe akitiyan lati kọ wọn ni imọ Ọlọrun ati iwuwasi Kristẹni. Baba saba maa n gbadura ni etigbọ ọmọ rẹ, ki ọmọ naa le ranti orukọ Oluwa, ati ni ọjọ kan ki o le ṣe iranwọ ninu titan otitọ Rẹ kalẹ. Gbogbo anfani fun idagbasoke ti iwa wiwu, ati ti ọpọlọ wọn,

ti igbesi aye wahala wọn gba wọn laaye lati ní ni awọn obi wọnyi lo daradara. Wọn fi tọkantọkan tẹramọ pipese awọn ọmọ wọn silẹ fun igbesi aye onifọkansin ati eyi ti o wulo. Ninu iduroṣinṣin ati okun ìwà wọn, wọn maa n rorò mọ awọn ọmọ wọn ni igba miran; ṣugbọn nigba ti Alatunṣe naa ri wipe wọn ṣe aṣiṣe ni awọn ọna miran, eyi ti o fi ọwọ si ninu itọni wọn pọ ju eyi ti ko fi ọwọ si lọ.

Ni ile ẹkọ ti a ran lọ nigba ti o wa ni ọmọde, a fi iya jẹ, a tun wu iwa ipa si nigba miran. Aini awọn obi rẹ pọ debi pe nigba ti o ba n lọ si ile ẹkọ rẹ ni ilu keji, fun igba diẹ, o maa n kọ orin lati ile de ile ki o to le ri ounjẹ rẹ; ọpọ igba si ni ebi maa n paa.

Awọn ero èké nipa ẹsin ti wọn n bani lọkanjẹ ni akoko rẹ maa n dẹru ba a. Yoo dubule ni aṣalẹ pẹlu ọkan ibanujẹ, yoo maa fi ipaya wo ọjọ iwaju, o maa n wa ni ibẹru nigba gbogbo pẹlu ero wipe Ọlọrun jẹ onroro, onidajọ ti o buru, ti kii sii dari ji ni, dipo ki o ri bi Baba ọrun alaanu.

Sibẹ pẹlu gbogbo awọn irẹwẹsi nla yii, Luther fi tọkantọkan tẹsiwaju ninu ìpele giga iwuwasi ati imọ ti o fa mọ ọkan rẹ. O poungbẹ fun imọ, iwa ifọkansin rẹ ati ifẹ rẹ lati kọ nipa ohun ti o ṣe e ṣe, mu ki o nifẹ ohun ti o nipọn ti o si wulo, dipo ohun ti o wa fun aṣehan ti ko si jinlẹ.

Nigba ti o pe ọmọ ọdun meji-din-logun, o wọ ile ẹkọ giga ti Erfurt, ipo ti o wa nibẹ dara, ọjọ iwaju rẹ si dara nibẹ ju ti ti atẹyinwa lọ. Nipasẹ ìkówójọ ati iṣẹ ṣiṣe, awọn obi rẹ ni agbara lati fun ni ohun gbogbo ti o nilo. Ipa awọn ọrẹ rẹ ti wọn jẹ ọlọgbọn mu ki ibanujẹ ọkan tí ẹkọ rẹ lati ibẹrẹ wa kó ba, o dinku. O kọ nipa awọn onkọwe ti wọn dara julọ, o n fi tọkantọkan ko awọn ero ijinlẹ wọn jọ, o si n fi ọgbọn awọn ọlọgbọn ṣe ti ara rẹ. Labẹ inira awọn olukọ rẹ akọkọ o fi ami titayọ han, pẹlu awọn ayika ti wọn ṣe iranwọ fun ọkan rẹ, iṣọwọronu rẹ dagbasoke ni kiakia. Ẹmi iranti, ironu ti o ja fafa, iṣọwọronu ti o lókun, ati afiyesi laisimi, awọn nnkan wọnyi gbe soke tente laarin awọn ẹlẹgbẹ rẹ. Ilana ẹkọ jẹ ki iye rẹ o muna si, o jẹ ki awọn ero kan o maa lọ ninu ọpọlọ rẹ, o si fun ni afiyesi ti o mu bi abẹ; wọn n pese rẹ silẹ fun awọn wahala aye rẹ.

Ibẹru Ọlọrun n gbe ninu ọkan Luther, eyi ran lọwọ lati ni iduroṣinṣin, o si jẹ ki o ni ẹmi irẹlẹ niwaju Ọlọrun. O ni imọlara igbẹkẹle rẹ ninu iranlọwọ Ọlọrun, ko si baku lati bẹrẹ ọjọ kọọkan pẹlu adura, ọkan rẹ si n bẹbẹ fun itọsọna ati iranlọwọ nigba gbogbo. O saba maa n sọ wipe, “Gbigbadura daradara ni aabọ eyi ti o dara julọ ninu ẹkọ.”

Ni ọjọ kan nigba ti o n yẹ awọn iwe wo ninu ile ikowe-pamọsi, Luther ri Bibeli ni ede Latin. Koi ti i ri iru iwe yii ri. Ko tilẹ mọ wipe iru rẹ wa. O gbọ nipa awọn abala Iyinrere ati Episteli ti a maa n ka

si awọn eniyan nigba isin gbogboogbo, o si ro wipe eyi ni gbogbo Bibeli. Bayi, fun igba akọkọ, o boju wo ọrọ Ọlọrun. O si awọn awẹ mimọ rẹ wo pẹlu ibẹru ati iyalẹnu; pẹlu ọkan rẹ ti o n mi gulegule, o ka awọn ọrọ iye wo funra rẹ, o si n danu duro loorekoore lati sọ wipe: "Bi Ọlọrun ba le fun mi ni iru iwe yii fun ara mi!" Awọn angẹli ọrun wa lẹgbẹ rẹ, itansan imọlẹ lati ọrun si fi ohun iṣura otitọ han si iye rẹ. O maa n bẹru lati ṣe si Ọlọrun, ṣugbọn nisisinyii, idaniloju nipa ipo rẹ gẹgẹ bi ẹlẹṣẹ mu lọkan ju ti tẹlẹ lọ.

Ifẹ atọkanwa lati ni ominira kuro lọwọ ẹṣẹ ati lati ri alaafia pẹlu Ọlọrun dari rẹ nikẹyin lati gbe igbesi aye ajẹjẹ ẹsin, o si jọwọ ara rẹ fun iṣesi awọn ajẹjẹ ẹsin. Nibi o nilo lati ṣe awọn iṣẹ ti wọn yẹpẹrẹ ẹni, o n tọrọ bárà lati ile de ile. O wà ni asiko ti eniyan maa n wọna fun ibọwọfun ati imọyi-ẹni, nitori naa, awọn iṣẹ pẹpẹẹpẹ wọnyi ko ba a lara mu rara; ṣugbọn o fi suuru fi ara da irẹnisilẹ rẹ, pẹlu igbagbọ wipe wọn ṣe pataki nitori ẹṣẹ rẹ.

Gbogbo akoko ti o ba yọ silẹ ninu iṣẹ ojumọ rẹ ni o maa n lo lati kẹkọ, o maa n fi orun dun ara rẹ, o si n ṣe aroye nitori akoko ti o n lo lati jẹ ounjẹ perete rẹ. Ju ohun gbogbo lọ o fẹran lati maa kọ ẹkọ ọrọ Ọlọrun. O ti ri Bibeli kan ti a fi ẹwọn de mọ ogiri ile ẹsin, nibẹ si ni o saba maa n lọ. Bi idalẹbi ẹṣẹ rẹ ti n jinlẹ si, o wa ọna lati ri alaafia ati idariji nipasẹ iṣẹ ọwọ ara rẹ. O gbe igbesi aye ti o nini lara julọ, o n ro lati tẹri awọn iwa buburu rẹ ba pẹlu awẹ, iṣọ oru, ati ifiyajẹ ara ẹni, awọn iwa ti igbesi aye ajẹjẹ ẹsin ko mu kuro. Ko yẹra kuro ninu ifiyajẹ ara ẹni nipasẹ eyi ti yoo fi ri ọkan mimọ ti yoo jẹ ki o le duro pẹlu idalare niwaju Ọlọrun. Nigba ti o ya, o sọ wipe, "Nitootọ, mo jẹ alufa onifọkansin, mo si tẹle awọn ilana ẹgbẹ mi pẹlu ofin tótó ju bi mo ti le sọ lọ. Bi iṣe awọn alufa ba le mu awọn alufa de ọrun, o ye ki n le debẹ laiṣe aniani. . . . Bi mo ba tẹsiwaju diẹ si ni, n ba gbe ifiyajẹra-ẹni mi de oju iku." Nitori ifiyajẹra-ẹni yii agbara rẹ dinku, giri si maa n mu, ipa rẹ ko si kuro lara rẹ patapata. Ṣugbọn pẹlu gbogbo akitiyan rẹ, ọkan wuwo rẹ ko ri alaafia. Lẹyin-ọrẹyin o fere sọ ireti nu.

Nigbati o dabi ẹnipe ko si ireti mo fun Luther, Ọlọrun gbe ọrẹ ati oluranlọwọ dide fun. Staupitz ti o jẹ olufọkansin ṣe alaye ọrọ Ọlọrun fun Luther o si rọ ọ ki o maṣe wo ara rẹ mọ, ki o dawọ rironu lori ijiya ainipẹkun nitori riru ofin Ọlọrun duro, ki o si wo Jesu Olugbala rẹ ti n dari ẹṣẹ ji ni. "Dipo ki o maa fi iya jẹ ara rẹ nitori awọn ẹṣẹ rẹ, sọ ara rẹ si ọwọ Olurapada. Ni igbẹkẹle ninu Rẹ, ninu ododo igbesi aye Rẹ, ninu iku iwẹnumọ Rẹ. . . . Fi eti silẹ si Ọmọ Ọlọrun. O di eniyan ki O le fun ọ ni idaniloju ojurere Ọlọrun." "Fẹran Ẹni ti o kọkọ fẹ ọ." Bi onisẹ-iranṣẹ aanu ṣe sọrọ niyi. Awọn ọrọ rẹ mu Luther lọkan gan an

ni. Lẹyin ọpọlọpọ ijakadi pẹlu awọn aṣiṣe ti o ti gba fun igba pipẹ, o ni oye otitọ, alaafia si wa si ọkan rẹ to n damu.

A gbe ọwọ le Luther lori gẹgẹ bi alufa, a si pe e lati ile awọn ajẹjẹ ẹsin lati wa jẹ ọjọgbọn ni ile ẹkọ giga ni Wittenberg. Nibi o kọ ẹkọ ọrọ Ọlọrun ni ede ti a fi kọ gan an. O bẹrẹ si ni i kọni ni ẹkọ lori Bibeli; o si n ṣi Saamu awọn Iyinrere, ati awọn Episteli paya si oye awọn ọpọ eniyan ti inu wọn dun lati gbọ. Staupitz, ọrẹ ati ọga rẹ, rọ ọ lati gun ori pẹpẹ iwaasu, ki o si waasu ọrọ Ọlọrun. Luther lọra, o ro wipe ohun ko to lati ba awọn eniyan sọrọ ni ipo Kristi. Lẹyin ironu ọlọjọ gbọọrọ, o tẹti si ipe awọn ọrẹ rẹ. O ti jẹ alagbara ninu Iwe Mimọ na, oore ọfẹ Ọlọrun si wa ni ori rẹ. Ijageere ọrọ rẹ fa awọn olugbọ rẹ lọkan, bi o ti n sọ otitọ ni ọna ti o ye kooro, ati pẹlu agbara jẹ ki otitọ o ye won, itara rẹ si fi ọwọ ba wọn lọkan.

Luther si jẹ ọmọ ijọ paadi nitootọ, ko si ni ero wipe oun le jẹ ohun miran. Ninu idari Ọlọrun, o bẹ Romu wò. Ẹsẹ ni o fi rin irin ajo rẹ, o n duro ni awọn ile awọn ajẹjẹ ẹsin ti wọn wa ni oju ọna. Ninu ile ẹsin kan ni Italy, ẹnu ya a nitori ọrọ, òǵo ati igbadun ti o ri. Nitori ti wọn n ri owo gọbọi, awọn alufa ibẹ n gbe inu ile ọlọla, wọn n wọ aṣọ olowo iyebiye, wọn si n jẹ onjẹ aladidun. Pẹlu ẹdun ọkan, Luther ṣe afiwe iṣẹlẹ yii pẹlu iṣẹra-ẹni ati ijiya igbesi aye rẹ. Ọkan rẹ bẹrẹ si ni poruuru.

Nikẹyin, o ri ilu ti o wa ni ori oke meje naa ni òkè réré. Pẹlu ìrò ọkan ti o jinlẹ, o nà gbalaja si ori ilẹ, o wipe: “Romu mimọ, mo ki ọ.” O wọ inu ilu naa, o bẹ awọn ile ijọsin wo, o fi eti si awọn orişirişi itan agbayanu ti awọn alufa n sọ, o si ṣe ohun gbogbo ti o yẹ ni ṣiṣe. Ni ibi gbogbo, o ri awọn iṣẹlẹ ti wọn ya a lẹnu ti wọn si ja láyà. O ri wipe aişedeede wọpọ ni aarin awọn alufa. O gbọ awọn ẹfẹ ti ko boju mu lati ọdọ awọn agba alufa, ẹru ba a nitori awọn iwa aimọ wọnyi, ani ti wọn n wu nigba ti wọn ba n gba mass. Bi o ti dara pọ mọ awọn alufa ati awọn ọmọ ilu, o ri iwa faaji ati aikora-ẹni-nijanu. Nibikibi ti o ba gboju si, dipo ki o ri iwa mimọ, iwa aimọ ni o ri. O kọwe wipe: “Ko si ẹni ti o le rò wipe wọn n wu iru iwa ẹṣẹ ati iwa ibajẹ yii ni Romu; eniyan ni lati ri wọn ki o si gbọ wọn ki o to le gbagbọ. Idi niyi ti wọn fi ni iwa lati maa sọ wipe, ‘Bi ọrun apadi ba wà, ori rẹ ni a kọ Romu le: ohun ni ọgbun nla nibi ti iruuru ẹṣẹ gbogbo ti n jade wa.”

Ninu ofin ti o ṣẹṣẹ jade, popu ṣe ileri idariji fun ẹnikẹni ti yoo ba gun “akasọ Pilatu” pẹlu eekun rẹ, eyi ni a sọ wipe Olugbala wa sọkalẹ lati ori rẹ nigba ti O n kuro ni gbọngan idajọ awọn Romu, ti a si gbe wa si Romu lati Jerusalẹmu ni ọna iyanu. Luther n fi tọkantọkan gun akasọ yii ni ọjọ kan nigba ti o gbọ ohùn kan bi ìró àrá ti o sọ fun wipe: “Olododo yoo wa nipa igbagbọ.” Romu 1:17. O dide duro lori

ẹsẹ rẹ, o si yara kankan kuro nibẹ pẹlu itiju ati ibẹru. Agbara ẹsẹ yii ko kuro ni ọkan rẹ. Lati akoko yii lọ o ri ni kedere ju ti atẹyinwa lọ bi gbigbẹkẹle iṣẹ eniyan fun igbala ti jẹ ẹtan to, ati bi igbagbọ nigba gbogbo ninu iṣẹ Kristi ti ṣe pataki to. Oju rẹ ṣi silẹ si awọn itanjẹ ijọ paadi, ko sile padé mọ. Nigba ti o yi oju rẹ kuro ni Romu, ọkan rẹ yi kuro pẹlu, lati akoko yii lọ, iyapa naa n fẹ si, titi ti ko fi ni ibaṣepọ kankan mọ pẹlu ijọ paadi.

Lẹyin ti o pada de lati Romu, Luther gba oye dokita ninu ẹkọ nipa Ọlọrun ni ile ẹkọ giga ni Wittenberg. Bayii o ni anfani ju ti tẹlẹ lọ lati fi ara rẹ jin fun Iwe Mimọ ti o fẹran. O ti jẹ ẹjẹ ọlọwọ lati fi pẹlẹkutu kọ ẹkọ ọrọ Ọlọrun, ki o si fi otitọ waasu rẹ, ki i si ṣe awọn ọrọ ati ikọni popu, ni gbogbo ọjọ aye rẹ. Ki i ṣe alufa ajẹjẹ ẹsin tabi ọjọgbọn lasan mọ, ṣugbọn ẹni ti a fi aṣẹ fun lati kede Bibeli. A ti pe e gẹgẹ bi oluṣọ aguntan lati bọ agbo Ọlọrun ti wọn n pebi ti wọn si n poungbe fun otitọ. O fi igboya sọ wipe awọn Kristẹni ko gbọdọ gba ikọni kankan ayafi eyi ti o ba duro lori aṣẹ Iwe Mimọ. Awọn ọrọ wọnyi ṣe akọlu si ipilẹ agbara ijọ paadi. Wọn ni awọn koko ọrọ to ṣe pataki fun iṣẹ Atunṣe.

Luther ri ewu ti o wa ninu gbigbe ọrọ eniyan ga ju ọrọ Ọlọrun lọ. O fi igboya tako ero aigbagbọ awọn ọmọwe, o si tako ero eniyan ati awọn ẹkọ nipa Ọlọrun ti wọn ti ni ipa lori awọn eniyan fun igba pipẹ. O ta iru awọn ẹkọ wọnyi nu bi eyi ti ko nitumọ, ti o tun lewu, o si wa ọna lati dari ọkan awọn olugbọ rẹ kuro ninu ọgbọn ẹwẹ awọn elero ijinlẹ ati awọn ti n kọni nipa Ọlọrun, ki o si yi si awọn otitọ ti awọn woli ati awọn apostoli fi kọni.

Awọn iṣẹ iranṣẹ ti wọn ṣe iyebiye ni o fi fun awọn ọpọ ero ti wọn n tẹti si ọrọ rẹ. Wọn koi ti i gbọ iru awọn ikọni yii ri. Iroyin ayọ ifẹ Olugbala, idaniloju idariji ati alaafia nipasẹ ẹjẹ iwẹnumọ Rẹ, mu inu wọn dun, o si sọ ireti ainipẹkun ji ninu wọn. A tan ina kan ni Wittenberg, eyi ti itansan rẹ yoo tan de opin aye, ti yoo si maa mọlẹ si titi di opin akoko.

Ṣugbọn imọlẹ ati okunkun ko le jumọ wa papọ. Ijakadi ti ko le farasin wa laarin otitọ ati èké. Lati di ọkan mu ati lati gbeja rẹ tumọ si wipe a yoo tako ekeji, a yoo si bi i subu. Olugbala wa funra Rẹ sọ wipe: "Emi ko wa lati ran alaafia, bikoṣe ida." Matiu 10:34. Lẹyin ọdun diẹ ti iṣẹ Atunṣe bẹrẹ, Luther sọ wipe: "Ki i ṣe wipe Ọlọrun n dari mi, ṣugbọn O n ti mi siwaju. O n gbe mi lọ. Emi ki i ṣe ọga ara mi. Mo fẹ lati wa ni alaafia; ṣugbọn a sọ mi si aarin rukerudo ati ijakadi." Bayi, a ṣe fa a sinu wahala naa.

Ijọ Romu ti sọ oore ọfẹ Ọlọrun di okoowo. A gbe tabili awọn ti n pa owo da (Matiu 21:12) si ẹba pẹpẹ rẹ, ayika si kun fun igbe awọn

ti n ṣe katakara. Nitori ati ko owo jọ fun kikọ ile ijọsin Peteru mimọ ni Romu, popu gbe idariji ẹṣẹ sita fun tita ni gbangba. A yoo kọ tẹmpili kan fun ijọsin Ọlọrun pẹlu owo ẹṣẹ—a yoo gbe okuta igun rẹ ro pẹlu èrè aiṣedeede! Ṣugbọn ọna kan naa gan ti Romu lo lati ko ọrọ jọ ni o ṣe ikọlu ti o lagbara julọ si agbara ati titobi rẹ. Eyi ni o ta eyi ti o lagidi julọ ti o si ṣe aṣeyọri julọ ninu awọn ọta ẹsin ijọ paadi ji, ti o si yọri si ogun ti o mi itẹ popu, ti o si ja ade onipele mẹta bọ kuro ni ori rẹ.

Tetzel, ẹni ti a ran lati wa ta idariji ẹṣẹ ni Germany ti jẹbi awọn ẹṣẹ nla si ilu ati si ofin Ọlọrun, ṣugbọn nitori pe o bọyọ kuro ninu awọn ijiya ti o yẹ fun awọn ẹṣẹ rẹ, a yan an lati ṣe iṣẹ ojukokoro, ati iṣẹ oniwaibajẹ fun popu. Pẹlu ainitiju nla, o n pa awọn irọ ti wọn han kedere, o si n sọ awọn itan ti o yanilẹnu lati tan awọn eniyan alaimọkan, ti wọn le gba ohunkohun gbọ jẹ. Bi o ba ṣe wipe wọn ni ọrọ Ọlọrun ni, a ki bati ṣe bẹyẹn tan wọn jẹ. Ki a baa le fi wọn si abẹ akoso ijọ padi, lati le fi kun agbara ati ọrọ awọn adari olojukokoro rẹ, ni a ṣe fi Bibeli pamọ kuro ni ọdọ wọn.

Bi Tetzel ti n wọ inu ilu kan, iranṣẹ kan n lọ niwaju rẹ, ti n kigbe wipe: “Oore ọfẹ Ọlọrun ati ti baba mimọ wa si ẹnu ọna yin.” Awọn eniyan si tẹwọgba opuro asọrọ-odi naa afi bi ẹnipe òhun ni Ọlọrun funra Rẹ ti o sọkalẹ wa lati ọrun wa si ọdọ wọn. A gbe okoowo ẹlẹgan yii kalẹ sinu ile ijọsin, Tetzel si gun ori pẹpẹ iwaasu, o n bu iyin fun idariji ẹṣẹ yii gẹgẹ bi ẹbun Ọlọrun ti o dara julọ. O sọ wipe nipa agbara iwe aṣẹ idariji rẹ, gbogbo ẹṣẹ ti ẹni ti o ba ra a ba ṣẹ lẹyin eyi ni a o dari rẹ ji, ati wipe ironupiwada ko ṣe pataki.” Ju eyi lọ, o fi da awọn olugbọ rẹ loju wipe ki i ṣe wipe iwe aṣẹ idariji yii ni agbara lati gba alaaye là nikan, ṣugbọn o le gba awọn oku la pẹlu; wipe lọgan ti owó naa ba ti balẹ ninu apoti ikowopamọ si, ọkan ẹni ti a tori rẹ san owo naa yoo kuro ninu ibi ifiyajẹni, lọ si ọrun.

Nigba ti Simon Magus fẹ ra agbara lati ṣe iṣẹ iyanu lọwọ awọn apostoli, Peteru da lohun wipe: “Ki owo rẹ o ṣegbe pelu rẹ, nitori ti iwọ ro wipe a le fi owo ra ẹbun Ọlọrun.” Iṣe 8:20. Ṣugbọn ọpọ awọn eniyan ni wọn n du ọja Tetzel. Wura ati fadaka n san wọ inu apo iṣura rẹ. O rọrun lati ni igbala ti a le fi owo rà ju eyi ti o nilo ironupiwada, igbagbọ, ati iṣẹ afọkanṣe lati tako, ati lati bori ẹṣẹ lọ.

Awọn ọmọwe ati olufọkansin ninu Ijọ Romu ti tako ikọni rira idariji ẹṣẹ, ọpọlọpọ si wa ti wọn ko ni igbagbọ ninu irọ ti o tako ironu ati ifihan yii. Ko si awọn agba alufa ti o gboya lati sọ ọrọ tako okoowo ẹṣẹ yii; ṣugbọn ọkan awọn eniyan ko balẹ mọ, o si ti bẹrẹ si ni i poruuru, ti ọpọ n fi tọkantọkan beere boya Ọlọrun ko ni ṣiṣẹ nipasẹ ohun èlò kan lati fọ ijọ Rẹ mọ.

Bi o tilẹ jẹ wipe Luther si jẹ ọmọ ijọ paadi tọkantọkan, o korira ọrọ awọn asọrọ odi ti n ta idariji ẹṣẹ yii. Ọpọ awọn ọmọ ijọ rẹ ni wọn ti ra iwe aṣẹ idariji ẹṣẹ, wọn wa bẹrẹ si ni wa si ọdọ alufa wọn, wọn n jẹwọ awọn ẹṣẹ wọn lorişirişi, wọn si n reti ki a dari ji wọn, ki i ṣe nitori pe wọn ronupiwada, ti wọn si fẹ ṣe atunṣe, ṣugbọn nitori pe wọn ti ra iwe fun idariji ẹṣẹ. Luther kọ lati dari ji wọn, o si kilọ fun wọn wipe, ayafi bi wọn ba ronupiwada ki wọn si yi igbesi aye wọn pada, wọn yoo ṣegbe ninu ẹṣẹ wọn. Ninu iporuuru ọkan wọn pada si ọdọ Tetzel lati ṣe aroye wipe ẹni ti wọn jẹwọ ẹṣẹ wọn fun ko gba iwe aṣẹ wọn; awọn kan tun fi igboya sọ wipe ki a da owo wọn pada. Inu bi alufa oníbárà yii. O ṣẹ èpè ti o buru jai, o mu ki a da ina si aarin ilu, o si sọ wipe: “oun ti gba aṣẹ lati ọdọ popu lati dana sun gbogbo ẹlẹkọ odi ti yoo ba gbero lati tako iwe idariji ẹṣẹ rẹ ti o jẹ mimọ julọ.”

Luther wa fi igboya bẹrẹ iṣẹ rẹ gẹgẹ bi olugbeja otitọ. A gbọ ohùn rẹ lati ori pẹpẹ, o n ṣe ikilọ ẹlẹru kikankikan. O fi bi ẹṣẹ ti buru to han awọn eniyan, o si kọ wọn wipe ko le ṣe e ṣe fun eniyan, pẹlu iṣẹ ọwọ rẹ, lati din ẹbi ẹṣẹ rẹ ku, tabi lati bọ kuro ninu ijiya rẹ. Ko si ohun kan ti o le gba ẹlẹṣẹ la ayafi ironupiwada si ọdọ Ọlọrun ati igbagbọ ninu Kristi. A ko le fi owó ra oore ọfẹ Kristi; ẹbun ọfẹ ni. O gba awọn eniyan niyanju lati maṣe ra idariji ẹṣẹ, ṣugbọn ki wọn fi igbagbọ wo Olurapada ti a kan mọ igi. O ṣe alaye iriri kikoro ara rẹ nigba ti o n ṣiṣẹ lasan nipa iyẹpẹrẹ ara ẹni, ati ifiya-jẹ-ara ẹni lati le ri igbala, o si fi da awọn olugbọ rẹ loju wipe nipa gbigbe oju kuro ni ara oun, ati gbigbagbọ ninu Kristi ni oun fi ri alaafia ati ayọ.

Bi Tetzel ti n tẹsiwaju ninu ọja rẹ ati awọn ọrọ alaiwabi-ọlọrun rẹ, Luther pinu lati lo ọna ti o lagbara si lati tako awọn iṣekuṣe wọnyi. O ri ọna kan laipẹ. Ọpọlọpọ ère wa ni ile ijọsin Wittenberg, eyi ti a maa n fi han awọn eniyan ni awọn ọjọ mimọ kan, a si n ṣe idariji ẹṣẹ ni kikun fun gbogbo awọn ti wọn ba bẹ ile ijọsin wò ti wọn si ṣe ijẹwọ ẹṣẹ ni akoko naa. Ni awọn ọjọ wọnyi, awọn eniyan pupọ ni wọn maa n wa sibẹ. Eyi ti o ṣe pataki julọ ninu awọn ọjọ wọnyi, ajọdun gbogbo awọn eniyan mimọ, n bọ lọna. Nigba ti o ku ọla, Luther darapọ mọ awọn eniyan ti wọn n lọ si ile ijọsin, o si lẹ iwe kan ti o fi kókó ọrọ marun-din-lọgọrun tako ikọni nipa tita idariji ẹṣẹ mọ ilẹkun rẹ. O kede ifẹ rẹ lati ṣe awijare si gbogbo awọn koko wọnyi ni ọjọ keji ninu ile ẹkọ giga, fun ẹnikẹni ti o ba fẹ ṣe atako wọn.

Gbogbo eniyan ni wọn fiyesi awọn akiyesi rẹ. A ka a ni akatunka, a tun ṣe atunsọ rẹ ni ibi gbogbo. Irọkẹkẹ nla bẹ silẹ ninu ile ẹkọ giga, ati ni gbogbo ilu naa. O fihan pẹlu awọn afiyesi wọnyi wipe a ko fun popu tabi ẹnikẹni ni agbara lati dari ẹṣẹ jini. Irọ patapata gbaa ni gbogbo ilana naa,—ète lati gba owó nipa titan awọn eniyan

alaimọkan jẹ lasan ni,—ète Satani lati pa gbogbo ọkan awọn ti wọn ba gbẹkẹle irọ rẹ run ni. A tun fihan kedere wipe iyinrere Kristi ni ohun ẹṣọ ti o ṣe iyebiye julọ ti ijọ ni, ati wipe lọfẹ ni a fi oore ọfẹ Ọlọrun ti a fihan ninu rẹ fun gbogbo ẹni ti o ba wa pẹlu ironupiwada ati igbagbọ.

Awọn afiyesi Luther fa ijiroro; ṣugbọn ko si ẹni ti o ni igboya lati pe wọn nija. Awọn ohun ti o kọ silẹ ti tan kalẹ de gbogbo Germany laipẹ ọjọ, lẹyin ọsẹ diẹ, o ti de gbogbo ilẹ ti a ti n ṣe ẹsin Kristẹni. Ọpọlọpọ awọn atẹle ẹsin Romu ti wọn jẹ onifọkansin, ti wọn ri ti wọn si n kaanu nitori awọn iwa ibajẹ ti won n gbilẹ kan ninu ijọ, ṣugbọn ti wọn ko mọ bi wọn yoo ti da duro, ka awọn afiyesi wọnyi pẹlu ayọ nla, wọn si ri ohùn Ọlọrun ninu wọn. Wọn ri wipe Oluwa ninu oore ọfẹ Rẹ na ọwọ Rẹ lati da iwa ibajẹ ti o n yara kankan gbilẹ si ti o n ti Romu jade wa yii duro. Awọn ijoye ati awọn alaṣe ilu n yọ labẹnu wipe a dá agbara onigberaga ti a ko le yẹ ipinu rẹ wò yii duro.

Ṣugbọn ọpọ ero ti wọn fẹran ẹṣẹ, ti wọn si jẹ alaimọkan bẹru nitori pe a ti gbá awọn ẹtan ti wọn pa ibẹru wọn lẹnumọ kuro. Awọn alufa ẹlẹtan ti a da duro ninu iṣẹ gbigbe iwa ibajẹ larugẹ ri wipe wahala ti de ba ọna ati ri owó wọn, wọn binu, wọn si parapọ lati fi idi ẹtan wọn mulẹ. Alatunṣe naa yoo pade awọn olufisun kikoro. Awọn kan fi ẹsun kan an wipe o wuwa laironu pẹlu igbonara. Awọn miran fi ẹsun kan an wipe ti inu ara rẹ ni o ṣe, wipe ki i ṣe Ọlọrun ni o n dari rẹ, ṣugbọn igberaga ati ìyájú ni o n tì í. O dahun wipe, “Tani ko mọ wipe ko si ẹni ti o n gbe ero tuntun sita ti ko ni dabi ẹnipe o n gberaga, ti a ko si ni fi ẹsun kan wipe o n da wahala silẹ? . . . Kini idi ti a fi pa Kristi ati gbogbo awọn ajẹriku? Nitori ti o dabi ẹnipe wọn fi igberaga kẹgan ọgbọn akoko wọn ni, ati wipe wọn n fi imọ tuntun kọni laikọkọ fi irẹlẹ gba imọran ero awọn agba.”

O tun sọ wipe: “A yoo ṣe ohunkohun ti mo ba ṣe, ki i ṣe pẹlu ọgbọn eniyan, bikoṣe pẹlu imọran Ọlọrun. Bi iṣẹ naa ba i ṣe ti Ọlọrun, tani yoo le da duro? ti ki i ba ṣe bẹẹ, tani o le mu ki o tẹsiwaju? Ki i ṣe ifẹ mi, ki i ṣe ti wọn, ki i ṣe tiwa; bikoṣe ifẹ Rẹ, Baba mimọ ti n bẹ ni ọrun.”

Bi o tilẹ jẹ wipe Ẹmi Ọlọrun ni O mi si Luther lati ṣe iṣẹ rẹ, yoo ri ijakadi kikan. Ẹgan awọn ọta rẹ, ṣiṣe afihan ero rẹ ni ọna ti ko tọ, ati bi wọn ti ronu lori iwa rẹ ati erongba rẹ ni ọna aitọ ati ni ọna ika, kọlu u bi igbi omi; wọn si ṣe iṣẹ wọn. Ọkan rẹ ti balẹ wipe awọn adari awọn eniyan ninu ijọ ati ninu ile ẹkọ yoo fi tayọtayọ darapọ mọ oun lati ṣe atunṣe. Ọrọ iwuri lati ọdọ awọn ti wọn wa ni ipo giga fun ni ayọ ati ireti. O ti n wọna fun igba ọtun ti n yọ fun ijọ. Ṣugbọn ọrọ iwuri ti yipada di ẹgan ati ibawi. Ọpọ awọn oloye ninu ijọ ati ni ilu ni wọn mọ wipe otitọ ni awọn afiyesi rẹ; ṣugbọn laipẹ jọjọ, wọn ri wipe awọn

ayipada nla ni yoo ṣẹlẹ bi wọn ba gba awọn otitọ wọnyi. Títún awọn eniyan ṣe, ki a si la wọn lọyẹ yoo din agbara Romu ku, yoo dawọ ọpọ owo ti n san sinu ile iṣura rẹ duro, yoo si din ọla ati igbadun awọn adari ijọ paadi ku jọjọ. Siwaju si, kikọ awọn eniyan lati ronu, ki wọn si wuwa gẹgẹ bi ẹni ti yoo jiyin iṣẹ rẹ, lati wo Kristi nikan ṣoṣo fun igbala, yoo bi itẹ popu wo, yoo si pa aṣẹ wọn run nikẹyin. Nitori idi eyi wọn kọ imọ ti Ọlọrun fifun wọn silẹ, wọn si doju ija kọ Kristi ati otitọ nipa titako ẹni ti O ran lati ṣi wọn niye.

Luther wariri bi o ti n wo ara rẹ—ẹnikan ṣoṣo ti o doju kọ agbara ti o ga julọ ni aye. Nigba miran, o ṣe iyemeji boya lootọ ni Ọlọrun dari oun lati tako aṣẹ ijọ. O kọwe wipe: "Tani mi ti n o fi tako ọlanla popu, ẹni ti . . . awọn ọba aye ati gbogbo aye n wariri niwaju rẹ? . . . Ko si ẹni ti o le mọ iya ti ọkan mi jẹ laarin awọn ọdun meji akọkọ wọnyi, ati iru iporuuru ọkan ati ainireti ti mo jin si." Ṣugbọn a ko fi i silẹ ki ọkan rẹ o bajẹ tan patapata. Nigba ti iranlọwọ eniyan pin, ó wo Ọlọrun nikan ṣoṣo, o si kẹkọ wipe oun le sinmi le ọwọ alagbara julọ ni, ki oun si wa ni alaafia.

Luther kọwe si ọrẹ iṣẹ Atunṣe kan wipe: "A ko le ni oye Iwe Mimọ nipa ẹkọ tabi iwoye. Ojuṣe rẹ akọkọ ni ki o bẹrẹ pẹlu adura. Gba adura ki Oluwa, ninu aanu nla Rẹ, o fun ọ ni oye tootọ nipa ọrọ Rẹ. Ko si olutumo ọrọ Ọlọrun miran ju Ẹni ti o kọ ọ lọ, gẹgẹ bi Oun funra Rẹ ti wi, 'Ọlọrun yoo kọ gbogbo wọn.' Maṣe reti ohunkohun lati inu iṣẹ rẹ, tabi lati inu oye rẹ: gbẹkẹle Ọlọrun, ati agbara Ẹmi Rẹ patapata. Gba eyi gbọ lati ọdọ ẹni ti o ti ni iriri."

Ẹkọ ti o ṣe pataki niyi fun awọn ti wọn ro wipe Ọlọrun ti pe wọn lati ṣe alaye awọn otitọ ti ìwòyí fun awọn miran. Awọn otitọ wọnyi yoo ru ikorira Satani ati ti awọn ti wọn fẹran ẹtan ti o gbe kalẹ soke. Ninu ijakadi pẹlu iwa buburu, ohun ti a nilo ju agbara ọgbọn ati ironu eniyan lọ.

Nigba ti awọn ọta ba n lo aṣa ati ẹkọ eniyan, tabi ti wọn n lo ọrọ ati aṣe popu, Luther pade wọn pẹlu Bibeli àni Bibeli nikan ṣoṣo. Ọrọ ti wọn kò lè fèsì sí wa nibẹ; nitori idi eyi ni awọn ti wọn ti di ẹru si aṣa ati ẹtan ṣe n kigbe fun ẹjẹ, bi awọn Ju ti kigbe fun ẹjẹ Kristi. Awọn onitara fun Romu n kigbe wipe, "Ẹlẹkọ odi ni." "Iṣọtẹ nla ni si ijọ bi a ba jẹ ki ẹlẹkọ odi buburu yii o wa laaye fun wakati kan si. Ẹ jẹ ki a gbe igi ibẹnilori ró fun ni kiakia!" Ṣugbọn Luther ko ṣubu si ọwọ ibinu wọn. Ọlọrun ni iṣẹ fun lati ṣe, a si ran awọn angẹli ọrun lati wa daabo bo o. Ṣugbọn ọpọlọpọ awọn ti wọn gba imọlẹ iyebiye yii lati ọwọ Luther ri idojukọ ibinu Satani wọn si fi igboya fi ara da ijiya ati iku nitori otitọ.

Awọn ti wọn ni òye ni ilẹ Germany fi iye si awọn ikọni Luther. Imọlẹ ti o ta awọn eniyan ji, ti o si tan imọlẹ si wọn tan jade lati inu

awọn iwaasu ati iwe rẹ. Igbagbọ ti o wa laaye n rọpo aṣa ti ko ni ẹmi ti ijọ ti wà ninu rẹ fun igba pipẹ. Awọn eniyan n padanu igbẹkẹle wọn ninu ẹtan ẹsin Romu lojoojumọ. Idena aimọkan n ya lulẹ. Ọrọ Ọlọrun ti Luther fi dan gbogbo ikọni ati igbagbọ wò dabi ida olojumeji ti n wọ ọkan awọn eniyan lọ. Ifẹ fun idagbasoke ẹmi sọji nibi gbogbo. Ìpebi ati ìpòùngbẹ fun ododo wa ni ibi gbogbo ni ọna ti a ko riri fun ọpọlọpọ igba seyin. Oju awọn eniyan, ti o ti n wo aṣa eniyan ati olubalaja aye fun igba pipẹ, wa n yi si Kristi ati Ẹni ti a kan mọ agbelebu pẹlu ironupiwada ati igbagbọ.

Bi ọrọ yii ti n tan kalẹ tun ru ibẹru awọn alaṣẹ ijọ paadi soke si. Luther gba ipe lati wa fi ara han ni Romu lati wa jẹjọ si awọn ẹsun ẹkọ odi. Aṣẹ yii dẹru ba awọn ọrẹ rẹ. Wọn mọ daju iru ewu ti o le wu u ninu ilu buburu naa, ilu ti o ti mu ẹjẹ awọn ajẹriku fun Jesu yó. Wọn tako bi o ti fẹ lọ si Romu, wọn wa sọ wipe ki a ṣe igbẹjọ rẹ ni Germany.

A gba èto yii wọle, a si yan aṣoju popu ti yoo ṣe igbẹjọ naa. Ninu aṣẹ ti popu fun aṣoju yii, a sọ wipe a ti ri Luther ni ẹlẹkọ odi ná. Nitori naa, a paṣẹ fun aṣoju naa lati "ṣe igbẹjọ, ki o si sẹ ẹ rọ ni kiakia." Bi o ba si duro gbọin, ti aṣoju naa ko si le sẹ ẹ rọ, a fun ni agbara lati "fi ofin de e ni gbogbo ilẹ Germany, lati lé gbogbo awọn ti wọn ba sun mọ kuro ni ilu, ki o fi wọn gegun, ki o si le wọn kuro ninu ijọ." Siwaju si, popu pa aṣoju rẹ laṣẹ, lati le fa ẹkọ odi buburu yii tu ti gbongbo ti gbongbo, lati le ẹnikẹni, laika ipo rẹ ninu ilu tabi ijọ si, ayafi ọba, ti o ba kọ lati mu Luther ati awọn atẹle rẹ, ki o si fa wọn le ibinu Romu lọwọ.

Nibi ni a ti fi iru ẹmi ti ẹsin popu ni gan an han. A ko ri ilana Kristẹni, tabi ti idajọ ninu gbogbo akọsile yii. Ibi ti Luther wa jinna si Romu pupọpupọ; koi ti i ni anfani lati ṣe alaye tabi lati wi awijare nipa igbagbọ rẹ; sibẹ, ki a to ṣe ayẹwo ẹjọ rẹ, a ti pe e ni ẹlẹkọ odi, ni ọjọ kan naa, ni a gba a niyanju, ni a fi ẹsun kan an, ni a ṣe idajọ rẹ, ni a da a lẹbi; ẹni ti o pe ara rẹ ni baba mimọ, aṣẹ kan ṣoṣo ti o ga julọ ti ko si le baku ninu ijọ ati ninu oṣelu, ni o si n ṣe gbogbo eyi!

Ni akoko yii, nigba ti Luther nilo ibakẹdun ati imọran ọrẹ tootọ, ipese Ọlọrun ran Melancthon wa si Wittenberg. O kere ni ọjọ ori, o ni iwa itiju, ko si gbẹkẹle ara rẹ, ìronu Melancthon ti o peye, imọ rẹ ti o jinlẹ, ati iṣọwọsọrọ rẹ ti o fanimọra, pẹlu iwa mimọ ati iwa ododo rẹ jẹ ki awọn eniyan o ka a si, wọn si jẹ ki o ni iyin ni oju wọn. Bi ijafafa rẹ ti pọ to, bẹẹ naa ni iwa pẹlẹ rẹ ti pọ to. Laipẹ, o fi tọkantọkan di atẹle iyinrere, ọrẹ ti Luther fi ọkan tan julọ, ati alatilẹyin rẹ ti o ṣeyebiye julọ; iwa pẹlẹ, iṣọraṣe, ati iwa iṣe deede rẹ jẹ idakeji igboya ati agbara Luther. Ibaṣepọ wọn ninu iṣẹ naa fun iṣẹ Atunṣe ni okun o si jẹ ohun imoriya nla fun Luther.

A yan Augsburg gẹgẹ bi ibi igbẹjọ, Alatunṣe naa si lọ sibẹ pẹlu ẹsẹ rẹ. Ibẹru nla bo ọpọlọpọ nitori rẹ. A ti ṣe ileri ni gbangba wipe a yoo mu, a o si pa ni oju ọna, awọn ọrẹ rẹ si rọ ọ ki o maṣe lọ. Wọn tilẹ tun rọ ọ ki o fi Wittenberg silẹ fun igba diẹ, ki o si wa aabo ni ọdọ awọn ti yoo fi tayọtayọ daabo bo o. Ṣugbọn ko ni fi ipo ti Ọlọrun fi si silẹ. O nilati fi igbagbọ tẹsiwaju lati duro ti otitọ laika awọn iji ti wọn ba bi lu u si. Ohun ti o n sọ ni wipe: “Mo dabi Jeremaya, ọkunrin onija ati wahala; ṣugbọn bi wahala wọn ba ṣe n pọ si, bẹẹ ni ayọ mi n di pupọ si. . . . Wọn ti ba iyin ati orukọ mi jẹ. Ohun kan ṣoṣo ni o ku; ara kiku yii ni: jẹ ki wọn gba a; wọn a fi wakati diẹ din ẹmi mi ku. Ṣugbọn ni ti ọkan mi, wọn ko le gba a. Ẹnikẹni ti o ba fẹ lati polongo ọrọ Kristi fun araye nilati maa reti iku nigba gbogbo.”

Iroyin wipe Luther ti de si Augsburg dun mọ aṣoju popu ninu pupọpupọ. O dabi ẹnipe ẹlẹkọ odi oniwahala ti gbogbo eniyan n fiyesi ti wa ni ikawọ agbara Romu, aṣoju naa si pinu wipe ko ni bọyọ. Alatunṣe naa ko gba iwe idaabobo. Awọn ọrẹ rẹ rọ ọ lati maṣe fi ara han niwaju aṣoju naa laisi ọkan, awọn funra wọn si ṣe akitiyan lati gba ọkan lati ọwọ ọba. Aṣoju naa ro, bi o ba ṣe e ṣe, lati fi ipa mu Luther ki o yi ọrọ rẹ pada, ati bi eyi ko ba ṣe e ṣe, ki o mu ki a gbe lọ si Romu ki o baa le gba ninu ipin Huss ati Jerome. Nitori naa, o fẹ fi ẹtan mu Luther nipasẹ awọn aṣoju rẹ, lati le mu ki o fi ara han niwaju oun laini iwe idaabobo, ki o baa le ṣe e bi o ti fẹ. Ṣugbọn Alatunṣe naa kọ lati ṣe eyi. Afi igba ti o to gba iwe ti ọba fi ṣe ileri lati daabo bo o ni o to fi ara han niwaju aṣoju popu.

Gẹgẹ bi iṣe wọn, awọn ẹlẹsin Romu ti pinu lati jere ọkan Luther nipa fifi ara han ni ọna iwapẹlẹ. Ninu ifọrọwanilẹnuwo rẹ, aṣoju naa ṣe bi ọrẹ tootọ; ṣugbọn o sọ wipe ki Luther o fi tọkantọkan gba aṣẹ ijọ, ki o si fi ohun gbogbo silẹ laisi ibeere tabi ariyanjiyan. Ko wo iwa ẹni ti o n ba lo daradara. Nigba ti o n fesi, Luther sọ bi o ti bọwọ fun ijọ, o sọ nipa ifẹ rẹ fun otitọ, ati imura rẹ lati dahun si ibeere ti o jẹyọ lori ohunkohun ti oun fi kọni, ati lati gbe ikọni rẹ si abẹ ipinu awọn ile ẹkọ giga kan. Ṣugbọn nigba kan naa, o tako iwa aṣoju naa ni fifẹ ki oun o yi ohùn pada laikọkọ fihan ibi ti oun ti ṣe aṣiṣe.

Esi kan ṣoṣo ti o wa ni: “Yi ohùn pada, yi ọrọ rẹ pada!” Alatunṣe naa fihan wipe Iwe Mimọ gbe ẹkọ ohun lẹsẹ, o si fi igboya sọ wipe òun ko le kọ otitọ silẹ. Nitori pe aṣoju naa ko le fèsì sí awọn ọrọ Luther, o bẹrẹ si ni i rojo eebu, ẹfẹ, ati ẹsín le lori, o n fi awọn akọsilẹ ijọ ati ti awọn Baba ijọ ru laarin, ko si fun Alatunṣe naa ni anfani lati sọrọ. Nigba ti o ri wipe apero naa ko le ni itumọ bi o ba n lọ bayii, Luther ba beere fun anfani lati kọ idahun rẹ silẹ.

Nigba ti o n kọwe si ọrẹ rẹ kan, o sọ wipe, “Nipa ṣiṣe eyi, ẹni ti a n fi iya jẹ ni anfani ni ọna meji; akọkọ ni wipe, a le gbé ohun ti a kọ silẹ siwaju elomiran lati ṣe idajọ le lori; ekeji si ni wipe, eniyan ni anfani ti o pọ si lati ṣiṣẹ lori ibẹru, ani ẹri ọkan onroro onigberaga ti o n sọrọ gbaugbau, ti i ba fi ariwo rẹ boni mọlẹ.”

Ninu iwanilẹnuwo ti o tẹle, Luther ṣe alaye awọn ero rẹ ni ọna ti o lagbara ti o si yeni yekeyeke, o si lo ọpọlọpọ ẹsẹ Iwe Mimọ lati fi gbe wọn lẹsẹ. Lẹyin ti o ka iwe yii soke tan, o fi le kádínà naa lọwọ, bi o tilẹ jẹ wipe o fi igberaga sọ ọ si ẹgbẹ kan, o n sọ wipe o kun fun awọn ọrọ asan ati ayọka ti ko ni itumọ. Inu wa bi Luther, o si da alufa onigberaga yii lohun pẹlu ọrọ rẹ—awọn aṣa ati ikọni ijọ—ti o si fọn gbogbo ero rẹ ká patapata.

Nigba ti alufa naa ri wipe awọn ọrọ Luther ko ṣe e fesi si, ko le ko ara rẹ ni ijanu mọ, o wa kigbe pẹlu ibinu wipe: “Yi ọrọ rẹ pada! Bi ko ba ri bẹẹ, maa ran ọ lọ si Romu, lati lọ fi ara han niwaju awọn adajọ ti a yan lati boju to ọrọ rẹ. Ma a lé iwọ ati gbogbo awọn atẹle rẹ, ati gbogbo awọn ti wọn ba fi oju rere wo ọ ni igba kan ri kuro ninu ijọ.” Nikẹyin o sọ pẹlu igberaga ati ibinu wipe: “Yi ọrọ rẹ pada, tabi ki o maṣe pada mọ.”

Alatunṣe naa yara kuro nibẹ pẹlu awọn ọrẹ rẹ, nipa eyi o n sọ ni gbangba wipe a ko gbọdọ reti ki oun yi ọrọ oun pada. Ki i ṣe ohun ti kadina naa gbero niyi. O ti dun ara rẹ ninu wipe oun yoo fi ipa sẹ Luther rọ. Bayi ti o wa ku oun ati awọn alatilẹyin rẹ nikan, o wo awọn iyoku pẹlu itiju nitori ibaku ti wọn ko lero ti o de ba ète wọn.

Ohun ti Luther ṣe nibi ni ayọrisi rere. Awọn eniyan ti wọn pejọ pọ ni anfani lati fi awọn mejeeji wé ara wọn, ati lati ṣe idajọ fun ara wọn iru ẹmi ti wọn fihan, ati bi ipo wọn ti ní okun, ti o si ti tọna si. Iyatọ naa ti pọ to! Alatunṣe naa, alaini-wahala, onirẹlẹ, o duro ṣinṣin, o duro ninu okun Ọlọrun, pẹlu otitọ ni ìhà rẹ; aṣoju popu jọ ara rẹ loju, o jẹ onijagidijagan, onigberaga, alainironu, ko ni ẹsẹ kan ṣoṣo lati inu Iwe Mimọ, sibẹ o n kigbe kikankikan wipe: “Yi ọrọ rẹ pada, tabi ki a ran ọ lọ si Romu fun ijiya.”

Bi o tilẹ jẹ wipe Luther ti gba iwe idaabobo, awọn ẹlẹsin Romu n pète lati mu ki wọn si ti i mọle. Awọn ọrẹ rẹ ro ọ wipe ko ni itumọ bi o ba duro diẹ si, o nilati pada si Wittenberg kiakia, ati wipe wọn nilati ṣora gidigidi ki wọn ma ba a mọ ohun ti o fẹ ṣe. Nitori naa, ki oju to mọ, o gun ẹṣin kuro ni Augsburg, pẹlu ẹṣọ kan ti alaṣe ilu naa fun. Pẹlu ibẹru ni orisirisi, o rọra la awọn adugbo ilu naa ti wọn ṣokunkun ti wọn si dakẹrọrọ kọja. Awọn ọta ti wọn ni ìkà n ṣe aisun, wọn n pète iparun rẹ. Ṣe yoo bọyọ kuro ninu ọdẹ ti a dẹ silẹ fun bi? Awọn akoko yii kun fun iporuuru ọkan ati adura atọkanwa. O de ibi ilẹkun

kekere kan ni ara ogiri ilu naa. A ṣi silẹ fun, oun pẹlu ẹṣọ rẹ si jade laisi idiwọ. Lọgan ti wọn de ita, awọn ti n sa asala naa ba mura si irin ẹṣẹ wọn; ki alufa naa to mọ wipe Luther ti salọ, o ti kọja ibi ti awọn oninunibini rẹ ti le ri mu. A ṣẹgun Satani ati awọn iransẹ rẹ. Ẹni ti wọn ro wipe o wa ni ikawọ wọn ti lọ, o sa asala bi ẹyẹ ti n salọ kuro lọwọ ikẹkun pẹyẹpẹyẹ.

Bi aṣoju naa ti gbọ wipe Luther ti salọ, o kun fun iyalẹnu ati ibinu. O gbero lati gba iyì nla fun ọgbọn ati iduroṣinṣin rẹ ninu iṣesi rẹ pẹlu ẹni ti n da ijọ laamu; ṣugbọn ijakulẹ ba ireti rẹ. O fi ibinu rẹ han ninu iwe ti o kọ si Frederick, afọbaje ti Saxony, o ba Luther wi gidigidi, o si sọ wipe ki Frederick o gbe Luther Alatunse naa wa si Romu, tabi ki o le kuro ni Saxony.

Ni awijare, Luther sọ wipe ki aṣoju naa tabi popu o fi aṣiṣe oun han oun lati inu Iwe Mimọ, o fi tọwọtọwọ jẹjẹ wipe oun yoo kọ awọn ikọni oun silẹ bi a ba le fihan wipe wọn tako ọrọ Ọlọrun. O si fi imoore rẹ han fun Ọlọrun nitori ti o ka oun yẹ lati jiya ninu iṣe mimọ.

Afọbaje naa koi ti i ni imọ ti o pọ nipa awọn ikọni ti a tunṣe yii, ṣugbọn igboya, okun, ati isọrọyeniyeke Luther mu lọkan; titi di igba ti a ba fihan wipe Alatunṣe naa ṣe aṣiṣe, Frederick pinu lati daabo bo o. O fesi si ohun ti aṣoju naa beere ninu iwe rẹ bayi pe: “Niwọn igba ti ọmọwe Martins ti fi ara han niwaju rẹ ni Augsburg, o yẹ ki iyẹn o tẹ ọ lọrun. A kò rò wipe wà á fẹ ki o yi ohùn rẹ pada laikọkọ fi han an ibi ti o ti ṣe aṣiṣe. Ko si ọkan ninu awọn ọmọwe ni agbegbe wa yii ti o ti i sọ fun mi wipe ikọni Luther ko ba ilana Ọlọrun mu, tabi pe ko ba ilana Kristẹni mu, tabi pe o jẹ ẹkọ odi.’ Ijoye naa si kọ lati ran Luther lọ si Romu, tabi lati le kuro ninu ilu.”

Afọbaje naa ri wipe ko si ikora-ẹni-nijanu mọ ni awujọ. A nilo iṣẹ atunṣe nla. A ko ba ti nilo ètò ati din iwa ibaje ku, ati fifi iya je oniwa ibajẹ, eyi ti o nira, ti o tun nánilówó, bi awọn eniyan ba mọ ti wọn si n ṣe igbọran si ofin Ọlọrun, ti wọn si tẹle ẹri ọkan ti o ni òye. O ri wipe ohun ti Luther n ṣiṣẹ lati ṣe ni eyi, inu rẹ si n dun labẹlẹ wipe agbara tuntun n fi ara han ninu ijọ.

O tun ri wipe Luther n ṣe daradara gẹgẹ bi ọjọgbọn ninu ile ẹkọ giga. Ọdun kan ṣoṣo ni o tii kọja lẹyin ti Alatunṣe naa lẹ awọn afiyesi rẹ mọ ile ijọsin, ṣugbọn iye awọn arinrinajo ti wọn n bẹ ile ijọsin naa wo ni ọjọ ajọdun gbogbo eniyan mimọ ti dinku gan an ni. Romu ko ri awọn olujọsin ati owó ọrẹ mọ, ṣugbọn awọn ẹgbẹ miran ti gba ipo wọn, awọn ti wọn n wa si Wittenberg, ki i ṣe awọn arinrinajo ti yoo maa jọsin awọn ère rẹ, ṣugbọn awọn akẹkọ ti yoo kun awọn gbọngan ikẹkọ rẹ. Awọn iwe Luther ti sọ ifẹ tuntun ninu Iwe Mimọ ji, ki i ṣe lati gbogbo Germany nikan, ṣugbọn lati awọn ilẹ miran ni

awọn akẹkọ ti n wa si ile ẹkọ ni Germany. Awọn ọdọmọkunrin ti wọn n wọ Wittenberg fun igba akọkọ “na ọwọ wọn si oke ọrun, wọn si n yin Ọlọrun nitori ti o jẹ ki imọlẹ otitọ o tan jade lati inu ilu yii wa, bii lati Sioni ni igba atijọ, ti o si tan de awọn orilẹ ede ti wọn jina rere lati ibẹ lọ.”

Luther koi ti i yipada kuro ninu awọn aṣiṣe ẹsin Romu tan. Ṣugbọn bi o ti n fi Ọrọ Mimọ ṣe afiwe awọn aṣẹ ati iwe ilana popu, o kun fun iyalẹnu. O kọwe wipe, “Mo n ka awọn aṣẹ awọn popu, . . . n ko si mọ boya popu ni aṣodi-si-Kristi naa funra rẹ, tabi apostoli rẹ, a ṣe afihan Kristi ninu wọn ni ọna ti ko tọ jọjọ, a tun kan An mọ agbelebu ninu wọn.” Sibẹ ni akoko yii, Luther si jẹ ọmọ Ijọ Romu, kò sì ní èrò wipe oun yoo kuro ninu agbo rẹ.

Awọn iwe ati ikọni Alatunṣe naa n tan de gbogbo orilẹ ede ti n ṣe ẹsin Kristẹni. Iṣẹ naa tan de Switzerland ati Holland. Awọn ẹda iwe rẹ de France ati Spain. A gba awọn ikọni rẹ bi ọrọ iye ni England. Otitọ naa tan de Belgium ati Italy. Ọpọlọpọ ni wọn taji kuro ninu orun ikú wọn si ayọ ati ireti igbesi aye igbagbọ.

Awọn atako Luther tubọ n pin Romu lẹmi, diẹ lara awọn alatako rẹ, ani awọn ọmọwe ninu ile ẹkọ giga ti wọn jẹ ti ijọ Katoliki sọ wipe, ẹnikẹni ti o ba pa alufa ọlọtẹ naa kò ní ní ẹṣẹ. Ni ọjọ kan, àjèjì kan, ti oun ti ìbọn ilewọ ni abẹ aṣọ rẹ lọ ba Alatunṣe naa o si beere ni ọwọ rẹ idi ti o fi n danikan rin. Luther dahun wipe, “Mo wa ni ọwọ Ọlọrun. Oun ni agbara ati asa mi. Kini eniyan le ṣe si mi?” Nigba ti o gbọ awọn ọrọ wọnyi, oju ajeji naa kọrẹ lọwọ, o si sa kuro niwaju rẹ afi bi ẹni ti o sa kuro niwaju angẹli ọrun.

Romu pinnu lati pa Luther run; ṣugbọn Ọlọrun ni aabo rẹ. Ibi gbogbo ni a ti n gbọ awọn ikọni rẹ—”ninu awọn abà oko ati ninu ile awọn ajẹjẹ esin obinrin, . . . ninu ile awọn eniyan pataki, ninu awọn ile ẹkọ giga, ati ninu aafin awọn ọba;” awọn eniyan pataki si dide ni iha gbogbo lati ran akitiyan rẹ lọwọ.

Ni aarin akoko yii, nigba ti Luther n ka iṣẹ Huss, o ri otitọ nla ti idalare nipa igbagbọ, eyi ti oun n fẹ lati tẹle ati lati fi kọni, wipe Alatunṣe ti Bohemia ti gba a gbọ. Luther sọ wipe, “Gbogbo wa, Pọlu, Augustine, ati emi funra mi, ti jẹ atẹle Huss ni aimọ!” O tẹsiwaju wipe, “Ọlọrun yoo ṣe abẹwo rẹ lori araye, nitori pe a waasu otitọ naa fun wọn ni ọgọrun ọdun sẹyin, ti wọn si jo níná.”

Ninu ipẹ si ọba ati awọn ijoye Germany nitori atunṣe ẹsin Kristẹni, Luther kọwe nipa popu wipe: “O jẹ ohun ti o buru jai lati ri ẹni ti o pe ara rẹ ni aṣoju Kristi, ki o maa gbe ninu ọrọ ti o ju ti gbogbo ọba lọ. Ṣe ohun ti o tumọ si lati dabi Jesu alaini niyi, tabi Peteru otoṣi? Wọn n sọ wipe oun ni oluwa aye! Ṣugbọn Kristi, Ẹni ti o n fọnu wipe oun

jẹ aṣoju Rẹ, sọ wipe, 'Ijọba mi ki i ṣe ti aye yii.' Ṣe akoso aṣoju le ju ti ọga rẹ lọ ni?"

O kọwe nipa awọn ile ẹkọ giga wipe: "Ẹru n bami gidigidi wipe awọn ile ẹkọ giga a di ẹnu ọna ọrun apaadi ayafi bi wọn ba ṣiṣẹ takuntakun lati ṣe alaye Iwe Mimọ, ki wọn si tẹ wọn mọ ọkan awọn ọdọ. Mo gba awọn eniyan niyanju lati maṣe fi ọmọ wọn si ibi ti Iwe Mimọ ko ti ni iṣakoso. Ibikibi ti awọn eniyan ko ba ti fi iye si ọrọ Ọlọrun ni aisimi yoo dibajẹ dandan ni."

A fi ipẹ yii ranṣẹ kaakiri ni gbogbo Germany, o si ni ipa ti o lagbara lori gbogbo awọn eniyan. Gbogbo orilẹ ede mi titi, ọpọlọpọ awọn eniyan si ko ara wọn jọ pọ lati duro ti ọpagun iṣẹ atunṣe. Awọn ọta Luther, ti ara wọn n gbona lati gbẹsan, rọ popu lati ṣe nnkan nipa rẹ. A ṣe ofin pe ki a tako awọn ikọni rẹ ni kiakia. A fun Alatunṣe naa ati awọn atẹle rẹ ni ọgọta ọjọ, lẹyin eyi bi wọn ko ba pa ohùn wọn dà, a yoo le gbogbo wọn kuro ninu ijọ.

Wahala nla ni eyi jẹ fun iṣẹ Atunṣe. Fun ọpọ ọdun sẹyin, aṣẹ ìléni kuro ninu ijọ lati ọdọ Romu maa n ṣeruba awọn ọba alagbara; o ti ko ègbé ati iparun ba awọn ijọba nla. Ni ibi gbogbo ni a ti maa n fi oju ibẹru ati ipaya wo gbogbo ẹni ti a ba ṣe idajọ yii fun; a yọ wọn kuro ninu ibaṣepọ pẹlu awọn alajọgbe wọn, a n ṣe si wọn bi ọdaran, ti a yoo si dọdẹ wọn titi ti wọn yoo fi parun tan. Oju Luther ko fọ si iji ti o fẹ bọ lu u yii; ṣugbọn o duro gbọin, o gbẹkẹle Kristi lati jẹ iranlọwọ ati aabo rẹ. O kọwe pẹlu igboya ati igbagbọ ajẹriku wipe: "Emi ko mọ ohun ti o fẹ ṣẹlẹ, bẹẹ si ni n ko fẹ mọ ọ. . . . Ẹ jẹ ki iji naa o bọ si ibi ti o ba fẹ, ẹru ko ba mi. Ewé kan ko le jabọ, ki Baba wa ma mọ si. Ṣe ko wa ni ṣe itọju wa! O jẹ ohun ti o rọrun lati ku nitori Ọrọ naa, nitori Ọrọ naa ti o di ara funra Rẹ ku. Bi a ba ku pẹlu Rẹ, a yoo gbe pẹlu Rẹ; ni lila ohun ti O ti la kọja ṣaaju wa kọja, a yoo wa pẹlu Rẹ ni ibi ti o wa, a yoo si gbe pẹlu Rẹ titi lae."

Nigba ti aṣẹ popu de ọdọ Luther, o sọ wipe: "Mo kẹgan rẹ, mo si kọlu u bi ohun ti ko tọ, ti o jẹ irọ. . . . Kristi funra Rẹ ni a da lẹbi ninu rẹ. . . . Inu mi dun nitori mo nilati jẹ iru iya yii nitori iṣẹ ti o dara julọ. Mo ni ominira ti o pọ si ninu ọkan mi ná; nitori nikẹyin mo mọ wipe popu ni aṣodi si Kristi, ati pe itẹ rẹ, ti Satani funra rẹ ni.

Sibẹ aṣẹ Romu ni ipa tirẹ. Ọgba ẹwọn, ijiya, ati ida jẹ ohun elo ti o lagbara lati mu ni ṣe igbọran. Awọn ojo ati alaimọkan n wariri niwaju aṣẹ popu; nigba ti gbogbo eniyan n ṣe ikaanu fun Luther, ọpọlọpọ ni wọn ro wipe ẹmi ṣe pataki ju ki a fi wewu fun iṣẹ atunṣe lọ. O dabi ẹnipe ohun gbogbo n tọka si wipe iṣẹ Alatunṣe naa ti fẹ pari.

Ṣugbẹn sibẹ, Luther ko bẹru. Romu ti fi gegun, awọn eniyan si n woran, wọn n wo boya yoo ṣegbe tabi ki o yi ọrọ rẹ pada. Ṣugbọn pẹlu

agbara nla, o ju ọrọ idalẹbi rẹ pada si, o si kede ipinu rẹ nigbangba lati jade kuro ninu idapọ rẹ titi lae. Niwaju awọn akẹkọ, ọmọwe, ati awọn ọmọ ilu gbogbo, Luther sun aṣẹ popu, pẹlu awọn iwe ofin ijọ, awọn iwe aṣẹ, ati awọn iwe miran ti wọn gbe agbara popu ró níná. O sọ wipe, "Awọn ọta mi ṣe ipalara si iṣẹ otitọ ninu ọkan awọn eniyan gbogbo nipa sisun awọn iwe mi nina, wọn si ṣe ipalara si ọkan wọn; nitori idi eyi, mo pa iwe wọn run pẹlu. Ijakadi alagbara ṣẹṣẹ bẹrẹ ni. Tẹlẹ mo si n ba popu ṣere ni. Mo bẹrẹ iṣẹ naa ni orukọ Ọlọrun; ki yoo si pari pẹlu mi, bikoṣe pẹlu agbara Rẹ."

Luther fesi si ẹgan awọn ọta rẹ ti wọn sọ wipe iṣẹ rẹ ko lagbara wipe: "Tani o mọ bi Ọlọrun ko ba yan mi tabi pe mi, bi eyi ko ba bà wọn lẹru, nipa kikẹgan mi wọn kẹgan Ọlọrun funra Rẹ? Mose dá wà ni oun nikan ni nigba ti o kuro ni Ijipti; Elijah nikan ni o da wa nigba ijọba Ahabu; Aisaya nikan ṣoṣo ni Jerusalẹmu; Isikiẹli nikan ṣoṣo ni Babiloni. . . . Ọlọrun ki i yan olori alufa, tabi eniyan nla kan gẹgẹ bi woli; ṣugbọn O saba maa n yan awọn ẹni rirẹlẹ, ti a kẹgan, O tilẹ yan oluṣọ-aguntan kan ri, Amosi. Ni gbogbo igba, awọn eniyan mimọ nilati ba awọn eniyan nla, awọn ọba, awọn ijoye, awọn alufa, ati awọn amoye wi, pẹlu ewu si ẹmi wọn. . . . Emi ko sọ wipe woli ni mi; ṣugbọn mo sọ ni pato wipe wọn nilati bẹru nitori pe mo wa ni emi nikan, ṣugbọn awọn pọ. Eyi damiloju wipe, ọrọ Ọlọrun wa pẹlu mi, ko si si ni ọdọ wọn."

Sibẹ pẹlu ijakadi nla ninu ara rẹ ni o fi pinu lati kuro ninu ijọ patapata. Laarin akoko yii o kọwe wipe: "Lojoojumọ ni mo n mọ bi o ti nira to lati kọ awọn iwa ti eniyan ti gba lati ọmọde silẹ. Ah! O ti ni mi lara to, bi o tilẹ jẹ wipe mo ni Iwe Mimọ ni ẹbá ọdọ mi lati fi da ara mi lare wipe mo nilati duro ni emi nikan lati tako popu, ki n si ri gẹgẹ bi aṣodi si Kristi! Iru ijiya wo ni ọkan mi koi ti i jẹ tan! Ọpọ igba ni mo maa n beere lọwọ ara mi iru ibeere ti o saba maa n jade lati ẹnu awọn atẹle popu wipe: 'Ṣe iwọ nikan ni o gbọn ni? Ṣe gbogbo eniyan wa le ṣe aṣiṣe? Bawo ni yoo ti ri nikẹyin bi o ba jẹ wipe iwọ ni o ṣe aṣiṣe, ti o si fa ọpọlọpọ awọn eniyan si inu aṣiṣe rẹ, tani yoo wa jẹbi ayeraye?' Bayi ni mo ṣe n ba ara mi jijakadi pẹlu Satani titi ti Kristi fi fi okun kun ọkan mi lati tako awọn iyemeji wọnyi pẹlu ọrọ Rẹ ti ko le baku."

Popu ti halẹ mọ Luther wipe bi ko ba yi ero rẹ pada, oun yoo le kuro ninu ijọ, bayi ati mu ileri naa ṣe. A tun pa aṣẹ miran, ti o yọ Alatunṣe naa kuro ninu Ijọ Romu patapata, ti o si fi ré gẹgẹ bi ẹni ifibu Ọrun, o fi orukọ gbogbo ẹni ti yoo ba gba ikọni rẹ kun. Ijakadi nla naa wa ṣẹṣẹ bẹrẹ.

Atako ni ipin gbogbo awọn ti Ọlọrun lo lati waasu awọn otitọ ti a nilo ni akoko wọn. Otitọ ti o ṣe pataki wa ni akoko Luther,—otitọ ti o ṣe pataki julọ ni akoko naa; otitọ ti o ṣe pataki tun wa fun ijọ loni.

Ẹni ti O n ṣe ohun gbogbo gẹgẹ bi ero ọkan Rẹ n fi eniyan sinu orișiriși ipo, yoo si fi ojuṣe ti o ṣe pataki ni akoko ti wọn n gbe ati ni ibi ti a fi wọn si han wọn. Bi wọn yoo ba mọ rírì imọlẹ ti a fi fun wọn, a yoo fi awọn otitọ ti wọn tobi ju eyi lọ han wọn. Ṣugbọn awọn eniyan ko fẹran otitọ loni gẹgẹ bi wọn ko ti fẹran rẹ ni akoko awọn atẹle popu ti wọn n ṣe atako Luther. Iru ifẹ kan naa lati gba ero ati ikọni eniyan dipo ọrọ Ọlọrun si wa gẹgẹ bi o ti wa ni igba iṣaaju. Awọn ti wọn n waasu otitọ ti o yẹ fun akoko yii ko gbọdọ reti wipe a yoo fi oju rere pupọ gba wọn ju bi a ti gba awọn alatunṣe ti iṣaaju lọ. Ijakadi nla laarin otitọ ati eke, laarin Kristi ati Satani yoo tubọ maa gbona si bi itan aye ti n lọ si opin.

Jesu sọ fun awọn ọmọ ẹyin Rẹ wipe: “Bi ẹyin ba n ṣe ti aye, aye yoo fẹran awọn eniyan tirẹ: ṣugbọn nitori ẹyin ki i ṣe ti aye, ṣugbọn mo ti yan yin kuro ninu aye, nitori naa ni aye fi korira yin. Ẹ ranti ọrọ ti Mo sọ fun yin, Iranṣẹ ki i tobi ju Oluwa rẹ lọ. Bi wọn ba ṣe inunibini si Mi, wọn yoo ṣe inunibini si yin pẹlu; bi wọn ba pa ọrọ Mi mọ, wọn yoo pa ti yin mọ pẹlu.” Johanu 15:19, 20. Oluwa tun sọ ọ kedere ni idakeji wipe: “Ègbé ni fun yin nigba ti gbogbo eniyan ba n sọrọ rere nipa yin! nitori bẹẹ ni awọn baba wọn ṣe si awọn woli èké.” Luku 6:26. Ẹmi aye ko si ni iṣọkan pẹlu ẹmi Kristi loni gẹgẹ bi ko ti ṣe wa ni igba iṣaaju, a ko si fi oju rere wo awọn ti wọn n waasu ọrọ Ọlọrun ninu iwa mimọ rẹ nisisinyi gẹgẹ bi a ko ti ṣe wo o nigba naa lọhun. Bi a ti ṣe atako si otitọ le yipada, ikorira naa le fi ara sin, ki o mà fi ara han sita kedere; ṣugbọn iru atako kan naa si wa, yoo si maa fi ara han titi fi di opin akoko.

8

Luther Niwaju Ìgbìmọ

Ọba miran, Charles V, gun ori itẹ ni Germany, awọn aṣoju Romu si yara kankan lọ ki ku oriire, wọn rọ ọba naa lati lo agbara rẹ lati tako iṣẹ Atunṣe. Ni ọna keji, afọbajẹ ti Saxony, ẹni ti o ran Charles lọwọ jọjọ lati de ori ipo, rọ ọ ki o maṣe gbe igbesẹ kankan lati tako Luther titi ti yoo fi gbọ ti ẹnu rẹ. Bayi ni a ṣe fi ọba naa sinu ipo isoro ati idamu nla. Ko si ohun ti o le tẹ awọn atẹle popu lọrun ayafi ki ọba o ṣe idajọ iku fun Luther. Afọbajẹ naa si sọ wipe, "ko si ẹnikẹni, ati ọba pẹlu ti o ti fihan wipe awọn akọsilẹ Luther ko tọna;" nitori naa, o beere ki "a fun Luther ni iwe idaabobo, ki o baa le fi ara han niwaju igbimọ onidajọ ti wọn jẹ ọmọwe, olufọkansin, ti wọn ki i si i ṣe oju isaju."

Gbogbo eniyan wa fiyè si ipade awọn ipinlẹ Germany ti a pe si Worms, ni kete lẹyin ti Charles gun ori itẹ ijọba naa. Awọn ọrọ oṣelu ti wọn ṣe pataki wà ti igbimọ yii yoo gbe yẹwo; fun igba akọkọ awọn ijoye Germany yoo pade ọba wọn ti o jẹ ọdọ yii ni ipade apero. Awọn ijoye ijọ ati ti ilu wá lati ibi gbogbo ni ilẹ naa. Awọn alaṣẹ ilu, awọn ẹni ti a bi ni ile ọlọrọ, awọn alagbara, ti wọn n daabo bo ohun ajogunba wọn; awọn alufa ọlọla fi ara han ninu ipo ọla ati agbara wọn; awọn ijoye ti wọn tun jẹ jagunjagun, ati awọn ti n gbe ohun ìjà wọn; ati awọn aṣoju lati ilẹ ajeji ati ilẹ jijina,— gbogbo wọn ni wọn pejọ pọ si Worms. Sibẹ ninu igbimọ nla naa, ẹni ti gbogbo awọn eniyan fi oju si lara julọ ni Alatunṣe ti Saxony.

Charles ti sọ fun afọbajẹ naa lati mu Luther dani wa si Igbimọ naa pẹlu rẹ, o si fun ni idaniloju idaabobo, ati ileri lati ṣe ijiroro laisi idiwọ, pẹlu awọn ti wọn da ara wọn loju, lori ọrọ ti o wa nilẹ yii. Ọkan Luther

n poruuru lati fi ara han niwaju ọba. Ailera ti n ba ni akoko yii; sibẹ, o kọwe si afọbajẹ naa wipe: “Bi n ko ba le lọ si Worms pẹlu ilera ti o péye, a yoo gbe mi lọ sibẹ pẹlu bi mo ti ṣe jẹ alailera yii. Nitori bi ọba ba n pemi, n ko gbọdọ jiyan wipe ipe Ọlọrun funra Rẹ ni. Bi wọn ba fẹ lati wu iwa ipa si mi, eyi si ṣe e ṣe daradara, (nitori ki i ṣe fun ikilọ wọn ni wọn fi paṣẹ fun mi pe ki n wa), mo fi ọrọ naa si ọwọ Oluwa. Ẹni ti O pa awọn ọdọmọkunrin mẹta nì mọ ninu ina ileru si wa laaye sibẹ, O si n jọba. Bi ko ba ni gbami silẹ, ẹmi mi ko ṣe pataki. E saa maṣe jẹ ki iyinrere o di ohun ẹgan ni oju awọn eniyan buburu, ki ẹ si jẹ ki a ta ẹjẹ wa silẹ ki wọn ma baa bori. Ki i ṣe fun mi lati yan boya iwalaaye mi tabi iku mi yoo ran igbagbọ awọn eniyan lọwọ julọ. . . . Ẹ maa reti ohunkohun lati ọdọ mi. . . ayafi sisa kuro ninu ewu, ati ìkó-ọrọ-ẹni-jẹ. Ni sisa n ko le salọ, bẹẹ si ni n ko le ko ọrọ mi jẹ.”

Bi iroyin ti tan kalẹ ni Worms wipe Luther yoo fi ara han niwaju Igbimọ, gbogbo ilu ba ru soke. Ẹnu ya Aleander, aṣoju popu ti a gbe ọrọ naa le lọwọ, o si binu. O ri wipe ayọrisi rẹ yoo ko ijamba ba iṣẹ ijọ padi. Lati ṣe iwadi si ọran ti popu ti ṣe idajọ idalẹbi le lori yoo ko ẹgan ba aṣẹ popu. Siwaju si o bẹru wipe iṣọwọsọrọ, ati iṣọwọronu ọkunrin yii, eyi ti o lagbara, le yi ọpọlọpọ ọkan pada kuro ninu iṣẹ popu. Nitori naa, o yara kankan ba Charles ṣọrọ lati tako bi Luther ti ṣe fẹ fi ara han ni Worms. Ni aarin akoko yii ni a gbe aṣẹ ti o yọ Luther kuro ninu ijọ jade; eyi pẹlu bi aṣoju naa ti gbe ọrọ naa kalẹ, mu ki ọba naa o gbọ ti rẹ. O kọwe si afọbajẹ naa wipe, bi Luther ko ba ni yi ọrọ rẹ pada, ki o duro ni Wittenberg.

Aṣeyọri yii ko tẹ lọrun, Aleander ṣiṣẹ pẹlu gbogbo agbara ati arekereke ti o wa ni ikawọ rẹ lati ri wipe a da Luther lẹbi. Pẹlu iforiti ti o yẹ fun iṣẹ ti o ni itumọ, o pe akiyesi awọn ijoye, alufa agba, ati awọn ọmọ igbimọ miran si ọrọ yii, o si n fi ẹsun “iyapa, iṣọtẹ, iwa aiwabiọlọrun, ati ọrọ odi” kan Alatunṣe naa. Ṣugbọn agbara ati itara ti aṣoju naa fi ṣe iṣẹ yii fi iru ẹmi ti o n lo o han kedere. Ohun ti gbogbo eniyan n sọ ni wipe, “Ẹmi ikorira ati ẹmi igbẹsan ni o n lo o, ki i ṣe ẹmi itara ati ifọkansin rara.” Ọpọlọpọ awọn ọmọ igbimọ naa tun wa ni ife lati fi oju rere wo iṣẹ Alatunṣe naa si.

Pẹlu itara ti o gbona si, Aleander ran ọba leti ojuṣe rẹ lati mu aṣẹ popu ṣe. Ṣugbọn ni abẹ ofin Germany, a ko le ṣe eyi laiṣe wipe awọn ijoye fi ọwọ si; nigbati inilara aṣoju yii bo o mọlẹ, Charles sọ fun wipe ki o gbe ọrọ rẹ wa siwaju igbimọ. “Ọjọ nla ni o jẹ fun aṣoju popu naa. Agbajọ naa tobi: ṣugbọn idi ti wọn fi pejọ pọ tobi ju u lọ. Aleander ni agbẹnusọ fun Romu, . . . ìyá ati adari gbogbo awọn ijọ.” Yoo wi awijare fun ipo Peteru niwaju gbogbo awọn ijoye inu ẹsin Kristẹni. “O ni ẹbun ọrọ sisọ, imura rẹ si ba bi iṣẹlẹ naa ti tobi to mu. Agbara

Ọlọrun dari Romu lati fi ara han ki o si sọrọ nipasẹ ẹni ti o dara julọ ninu awọn sọrọsọrọ rẹ niwaju igbimọ igbẹjọ pataki ti o da lẹbi yii." Awọn ti wọn fi oju rere wo Alatunṣe naa n wo ipa ti ọrọ Aleander yoo ni pẹlu iyemeji. Afọbajẹ ti Saxony ko si nibẹ, ṣugbọn o pasẹ fun awọn ijoye rẹ ti wọn wa nibẹ ki wọn kọ awọn ọrọ aṣoju naa silẹ.

Pẹlu gbogbo agbara ẹkọ ati ẹbun isọrọ, Aleander dide lati bi otitọ ṣubu. Lẹsẹlẹsẹ ni o n fi ẹsun kan Luther gẹgẹ bi ọta ijọ ati ilu, oku ati alaaye, awọn alufa ati ọmọ ijọ, awọn igbimọ ati ti awọn Kristẹni lasan. O sọ wipe, "Awọn aṣiṣe Luther pọ to bẹẹ gẹẹ" ti o le mu ki a sun "ẹgbẹrun lọna ọgọrun ẹlẹkọ odi nina."

Ni akotan o ṣe akitiyan lati kẹgan awọn ti wọn gbagbọ ninu igbagbọ ti a tunṣe naa: "Kini awọn atẹle Luther wọnyi jamọ? Ẹgbẹ awọn olukọ alafojudi, awọn alufa oniwa ibajẹ, awọn ajẹjẹ ẹsin ti n wuwa aimọ, awọn amofin alaimọkan, ati awọn ijoye ti a ti yọ nipo, pẹlu awọn ara ilu ti wọn ti ṣi lọna kuro ninu ohun ti o tọna. Ẹgbẹ ijọ Katoliki ti ju wọn lọ tó ni iye, ipá, ati agbara! Aṣẹ ajumọṣe kan lati inu igbimọ nla yii yoo la awọn òpè lọyẹ, yoo ki awọn ọlọgbọn nilọ, yoo jẹ ki awọn oniyemeji o ṣe ipinu wọn, yoo si fun awọn alailagbara ni okun."

Pẹlu iru awọn ohun ija yii ni a fi maa n kọlu awọn ti n waasu otitọ ni igba gbogbo. Iru iṣọwọronu kan naa ni a si n lo lati tako awọn ti wọn ba ni igboya lati waasu ọrọ Ọlọrun ni ailabawọn ni atako si awọn èké ti a ti fi idi wọn mulẹ. Awọn ti wọn ni ifẹ si ẹsin ti o gbajugbaja n sọ wipe, "Awọn wo ni wọn n waasu ikọni tuntun yii?" Wọn ko kàwé, wọn kere niye, wọn ko si ni ọrọ. Wọn sọ wipe wọn ni otitọ, ati wipe Ọlọrun ni o yan wọn. Wọn jẹ alaimọkan, a si n tan wọn jẹ. Ijọ wa ti pọ to ni iye, o si ti ni agbara to! Awọn ẹni nla ati ọmọwe ti pọ ni aarin wa tó! Agbara ti o wa ni ọdọ wa ti pọ tó!" Awọn iṣọwọronu wọnyi n ni agbara lori aye; ṣugbọn wọn ko ni itumọ ni ode oni gẹgẹ bi wọn ko ti ṣe ni itumọ ni akoko Alatunṣe naa.

Iṣẹ Atunṣe naa ko pari pẹlu Luther gẹgẹ bi ọpọlọpọ ti rò. Yoo tẹsiwaju titi di opin aye yii. Luther ni iṣẹ nla lati ṣe ni titan imọlẹ ti Ọlọrun jẹ ki o tan si sí awọn miran; sibẹ ko gba gbogbo imọlẹ ti o yẹ ki a fun araye. Lati akoko naa titi di isinsinyii, imọlẹ tuntun si n tan si inu Iwe Mimọ, awọn otitọ tuntun si n tan sita nigba gbogbo.

Ọrọ aṣoju yii ni ipa ti o pọ lori igbimọ naa. Ko si Luther nibẹ, lati ṣẹgun olugbeja popu pẹlu otitọ ọrọ Ọlọrun ti o da ṣaka, ti ko si ni abawọn. A ko ṣe akitiyan kankan lati gbeja Alatunṣe naa. O dabi ẹnipe gbogbo wọn ni ifẹ si, ki i ṣe lati da lẹbi pẹlu awọn ohun ti o fi kọni nikan, ṣugbọn bi o ba ṣe e ṣe lati fa ẹkọ odi naa tu. Romu ti jẹ anfani ti o dara julọ lati gbeja ara rẹ. Gbogbo awijare ti o le ṣe nipa ara rẹ ni o ti ṣe. Ṣugbọn ohun ti o fi ara han gẹgẹ bi iṣẹgun jẹ ami

ibaku. Lati akoko yii lọ, a yoo tubọ ri kedere si iyatọ ti o wa ni aarin otitọ ati èké bi wọn ti n wọya ija ni ojutaye. Lati igba naa lọ, ọkan Romu ko le balẹ bi i ti tẹlẹ mọ.

Nigba ti ọpọ awọn ọmọ igbimọ naa ko ni lọra lati fi Luther lé igbẹsan Romu lọwọ, ọpọlọpọ wọn ni wọn ri, ti inu wọn ko si dun si iwa ibajẹ ti o wa ninu ijọ, ti wọn si n fẹ ki ìyà ti awọn ara Germany n jẹ nitori iwa ibajẹ ati ojukokoro ijọ o dinku. Aṣoju naa ti fi iṣakoso popu han ni ọna ti o dara julọ. Bayi, Ọlọrun wa mi si ọkan lara awọn ọmọ igbimọ naa lati ṣe alaye ododo nipa awọn ayọrisi iwa onroro popu. Pẹlu iduroṣinṣin ti o yẹ ipo rẹ, Duke George ti Saxony dide laarin awujọ awọn ijoye naa, o si ṣe alaye kikun nipa awọn itanjẹ ati iwa èérí ẹsin popu, ati ayọrisi buburu ti wọn ni. Ni ipari, o sọ wipe: "Ara awọn iwa ibajẹ ti wọn n kigbe tako Romu ni iwọnyi. A ti pa gbogbo itiju ti si ẹgbẹ kan, ohun kan ṣoṣo ti wọn n wa ni . . . owó, owó, owó, . . . to bẹẹ gẹẹ ti oniwaasu ti o yẹ ki o kọni ni otitọ ko sọ ohun miran ayafi èké, ki i si i ṣe wipe a n fi ara da wọn nikan, ṣugbọn a n fun wọn ni ẹbun, nitori bi irọ wọn ba ti ṣe pọ to, bẹẹ ni ẹbun wọn yoo ti pọ to. Lati inu orisun yii ni omi idọti ti n san jade. Iwa ibajẹ laisi ikora ẹni nijanu n na ọwọ rẹ si ifẹ owo. . . . O maṣe o, awọn iwa ibajẹ ti awọn alufa n wu ni o n sọ ọpọlọpọ ọkan sinu ijiya ayeraye. A nilati ṣe atunṣe gbogboogbo."

Luther funra rẹ ko le sọ awọn ọrọ ti o tobi ju eyi lọ nipa awọn iwa ibajẹ popu; nitori pe ẹni ti o sọ ọrọ yii tun jẹ ọta pọnbele Alatunṣe naa tun jẹ ki awọn ọrọ rẹ o ni agbara si.

Bi a ba ṣi awọn eniyan inu awujọ naa loju ni, wọn i ba ri awọn angẹli Ọlọrun laarin wọn, ti wọn n tan imọlẹ lati bi okunkun irọ pada, ti wọn si n ṣi iye ati ọkan awọn eniyan silẹ lati gba otitọ. Agbara Ọlọrun otitọ ati ọgbọn ni o dari, ani, awọn ọta iṣẹ atunṣe, ti o si pese ọna silẹ fun iṣẹ nla ti a fẹ ṣe. Martin Luther ko si nibẹ; ṣugbọn a gbọ ohùn Ẹni ti O tobi ju Luther lọ ninu igbimọ naa.

Loju ẹsẹ, apero naa yan igbimọ alabẹṣekele kan lati ṣe akọsilẹ awọn inilara popu ti wọn di ẹru wuwo le awọn ara Germany lori. Ọpọlọpọ nnkan ni wọn kọ silẹ, ti wọn si fi le ọba lọwọ, pẹlu ẹbẹ wipe ki o yara kankan lati ṣe atunṣe si awọn aṣeju wọnyi. Awọn onkọwe naa sọ wipe, "Ẹ wo adanu nla si ọkan awọn Kristẹni, ẹ wo ikonilẹrùlọ, ẹ wo ilọnilọwọgba, nitori awọn ẹsun iwa ibajẹ ti wọn yi Olori ẹsin Kristẹni ka! Ojuṣe wa ni lati maṣe jẹ ki iparun ati itiju o de ba awọn eniyan wa. Nitori idi eyi, a fi tọwọtọwọ, ṣugbọn pẹlu ikanju rọ ọ lati paṣẹ atunṣe gbogboogbo, ki o si ri wipe o di ṣiṣe."

Igbimọ naa wa fẹ ki Alatunṣe naa o fi ara han niwaju wọn. Pẹlu gbogbo ẹbẹ, ẹhonu, ati ihalẹ Aleander, ọba fi ọwọ si nikẹyin, a si pe

Luther lati wa fi ara han niwaju igbimọ. A fi iwe idaabobo ti o fi da loju wipe yoo pada si ibi aabo ranṣẹ pẹlu ipe yii. Ojiṣẹ kan ti a ran lati mu wa si Worms ni o ko wọn wa si Wittenberg.

Ẹru ba awọn ọrẹ Luther, ọkan won si poruuru. Wọn mọ iru ẹtanu, ati ikorira ti wọn ni si, wọn bẹru wipe wọn le ma nani iwe idaabobo, wọn si rọ ọ ki o maṣe fi ẹmi rẹ wewu. O da wọn lohun: "Awọn atẹle popu ko fẹ ki n wa si Worms, ohun ti wọn fẹ ni idalẹbi ati iku mi. Ko si nitumọ. Ẹ maṣe gbadura fun mi, bikoṣe fun ọrọ Ọlọrun. . . . Kristi yoo fun mi ni Ẹmi Rẹ lati bori awọn iranṣẹ irọ wọnyi. Mo korira wọn ni igba aye mi; maa si bori wọn nipasẹ iku mi. Wọn n ṣiṣẹ ni Worms lati le fi ipa mumi yi ọrọ mi pada; eyi ni yoo si jẹ ìyí-ọrọ-padà mi: Mo sọ tẹlẹ wipe popu ni aṣoju Kristi; nisinsinyi, mo gbagbọ wipe oun ni ọta Oluwa wa, ati apostoli eṣu."

Luther ko danikan rin irin ajo ti o lewu yii. Yatọ si iranṣẹ ọba, awọn mẹta ninu awọn ọrẹ rẹ ti wọn duro ṣinṣin julọ ni wọn tẹle. Melancthon si fẹ lati tẹle wọn. Ọkan rẹ ti so pọ mọ ti Luther, o si fẹ lati tẹle, bi o ba ṣe e ṣe, si ọgba ẹwọn, tabi si iku. Ṣugbọn a ko gba a laaye. Bi Luther ba ku, ireti iṣẹ Atunṣe yoo wà lori ọdọ, alabaṣiṣẹpọ rẹ yii. Alatunṣe naa sọ bi o ti n kuro ni ọdọ Melancthon wipe: "Bi n ko ba pada, ti awọn ọta mi si pa mi, tẹsiwaju lati maa kọni, ki o duro gbọin ninu otitọ. Maa ṣiṣẹ ni ipo mi. . . . Bi o ba wa laaye, iku mi ki yoo jamọ nnkankan." Ibanujẹ bo awọn akẹkọ ati awọn ara ilu ti wọn pejọ pọ lati wo bi Luther ti n lọ. Ọpọlọpọ awọn eniyan ti iyinrere ti fi ọwọ ba lọkan, ki i pe o digboṣe pẹlu ẹkun. Alatunṣe naa si bẹrẹ irin ajo rẹ lati Wittenberg.

Ni oju ọna, o ri wipe ohun buburu ti o le ṣẹlẹ ko ibanujẹ ba awọn eniyan. Ninu awọn ilu miran, a bu ọla fun wọn. Bi wọn ti duro lati sun, alufa kan ti o jẹ ọrẹ wọn fi ibẹru rẹ han nipa fifi aworan alatunṣe ara Italy ti o jiya ijẹriku han Luther. Ni ọjọ keji, wọn gbọ wipe ati ṣe ofin wipe awọn iwe Luther ko dara ni Worms. Awọn iranṣẹ ọba n kede aṣẹ ọba, wọn n pe gbogbo eniyan lati ko awọn iṣẹ ti a ko gba laaye naa wa si ọdọ awọn alaṣẹ ilu. Iranṣẹ ọba naa bẹru boya Luther yoo ni aabo ninu igbimọ naa; o ro boya ẹru le maa ba a, o beere boya o si fẹ lati tẹsiwaju. O dahun wipe: "Bi a ba tilẹ le mi kuro ni gbogbo ilu, maa tẹsiwaju."

Ni Erfurt, a tẹwọgba Luther pẹlu ẹyẹ. Awọn ero ti wọn fẹran rẹ rọgba yi ka, o kọja laarin ilu ti o ti fi igba kan la kọja ri pẹlu àpò onibara rẹ. O bẹ yara rẹ ninu ile awọn ajẹjẹ ẹsin naa wo, o si ronu lori awọn ijakadi ti wọn jẹ ki imọlẹ ti n tan si gbogbo Germany o tan si ọkan oun. A rọ ọ lati waasu. A ti paṣẹ fun lati maṣe ṣe eyi, ṣugbọn iranṣẹ ọba fun ni aaye, alufa onibara, ti o ti fi igba kan ri jẹ ẹni ti o n ṣe iṣẹ ti o n yẹpẹrẹ ẹni ni ile awọn ajẹjẹ ẹsin, wa gun ori pẹpẹ iwaasu.

O sọ lati ara awọn ọrọ Kristi, “Alaafia fun yin” si awọn eniyan. O sọ wipe: “Awọn elero ijinlẹ, ọmọwe, ati onkọwe ti ṣe akitiyan lati kọ awọn eniyan ni ọna lati le ri iye ainipẹkun, wọn ko ṣe aṣeyege. Emi wa n sọ fun yin: . . . Ọlọrun ji Ọkunrin kan dide kuro ninu ipo oku, Jesu Kristi Oluwa, ki O baa le pa iku run, ki O le mu ẹṣẹ kuro, ki O si ti ilẹkun ọrun apaadi. Eyi ni iṣẹ igbala. . . . Kristi ti ṣẹgun! eyi ni iroyin ayọ; a gba wa la nipa iṣẹ rẹ, ki si i ṣe nipa iṣẹ wa. . . . Jesu Kristi Oluwa wa sọ wipe, ‘Alaafia ni fun yin; ẹ kiyesi ọwọ mi;’ o tumọ si wipe, Iwọ eniyan, kiyesi i! Emi ni, ani Emi nikan, ni o ko ẹṣẹ rẹ lọ, Mo si ti ra ọ pada; nitori naa iwọ ni alaafia, ni Oluwa wi.”

O tẹsiwaju lati fihan wipe igbagbọ tootọ yoo fi ara han ninu igbesi aye mimọ. “Niwọn igba ti Ọlọrun ti gba wa la, ẹ jẹ ki awa pẹlu o ṣe iṣẹ wa ni ọna ti yoo fi jẹ itẹwọgba ni ọwọ re. Njẹ iwọ jẹ ọlọrọ bi? lo ọrọ rẹ fun awọn alaini. Njẹ iwọ jẹ alaini bi? jẹ ki iṣẹ rẹ o ṣe itẹwọgba ni ọwọ awọn ọlọrọ. Bi o ba jẹ wipe iwọ nikan ni iṣẹ rẹ wulo fun, irọ patapata ni iṣẹ ti iwọ n ro wipe o n ṣe fun Ọlọrun.”

Awọn eniyan naa fi eti silẹ, afi bi ẹnipe a fi àbo mu wọn. A bu akara iye fun ọkan ti ebi n pa. A gbe Kristi ga ju awọn popu, alufa, ọba ati awọn alaṣẹ lọ. Luther ko sọ nipa ipo ewu ti o wa. Ko fẹ ki gbogbo eniyan o maa ro nipa oun tabi ki wọn maa ṣe ikaanu fun oun. O gbagbe ara rẹ nipa riro nipa Kristi. O fi ara rẹ pamo si ẹyin Ọkunrin Kalfari, afojusun rẹ kan ṣoṣo ni lati waasu Jesu, Olurapada ẹlẹṣẹ.

Bi Alatunṣe naa ti n lọ ninu irin ajo rẹ, ibi gbogbo ni a ti n fi tiyanutiyanu wo o. Ọpọ ero ni wọn yii ka ti awọn ọrẹ rẹ si n ki i nilọ nipa erongba awọn ẹlẹsin Romu. Awọn kan sọ wipe, “Wọn yoo sun ọ nina, wọn a sọ ọ di eeru bi wọn ti ṣe si John Huss.” Luther dahun wipe: “Bi wọn tilẹ da ina lati Worms de Wittenberg, ti o si jó ga de ọrun, emi yoo la a kọja ni orukọ Oluwa; maa fi ara han niwaju wọn; maa wọ ẹnu ẹranko buburu yii lọ, maa kan an ni eyín, maa si jẹwọ Jesu Kristi Oluwa.”

Iroyin wipe Alatunṣe naa ti de si Worms fa irọkẹkẹ nla. Awọn ọre rẹ bẹru nitori aabo rẹ; awọn ọta rẹ si bẹru nitori aṣeyọri iṣẹ wọn. A ṣa ipa kikankikan lati rọ ọ ki o maṣe wọ inu ilu naa. Awọn atẹle popu ran awọn eniyan si ti wọn gba a niyanju lati lọ si ile iṣọ ijoye ti o jẹ ọrẹ rẹ kan, nibi ti a ti le pari gbogbo wahala naa ni tubi inubi. Awọn ọrẹ rẹ n gbiyanju lati ru ibẹru rẹ soke nipa ṣiṣe alaye ewu ti o le wu u. Gbogbo akitiyan wọn ni o baku. Luther, laimikan, sọ wipe: “Bi awọn ẹmi eṣu ba le pọ ni Worms bi awọn àwo ìbolé, emi yoo si wọ inu rẹ lọ.”

Nigba ti o de Worms, ọpọ ero ni wọn pejọ pọ lati ki kaabọ. Iru awọn ero bayi ko pejọ pọ lati wa ki ọba funra rẹ. Irọkẹkẹ gba ilu kan, ohùn kan si n kọ orin arò laarin awọn ero gẹgẹ bi ikilọ nipa ohun ti o

n duro de Luther. Ṣugbọn “Ọlọrun yoo jẹ aabo mi” ni o sọ jade lẹnu bi o ti n sọkalẹ lati inu kẹkẹ ti a fi gbe.

Awọn atẹle popu ko gbagbọ wipe Luther yoo wa si Worms, ipaya si ba wọn nigba ti o de. Ọba yara pe awọn ijoye rẹ lati jiroro nipa ohun ti wọn yoo ṣe. Bişọbu kan, atẹle popu tọkantọkan, sọ wipe: “A ti jiroro lori ọrọ yii pẹ ju. Jẹ ki ọba o pa ọkunrin yii ni kiakia. Ṣebi Sigismund jẹ ki a pa John Huss? A ko ni ojuṣe lati fun ẹlẹkọ odi ni iwe idaabobo, tabi ki a bọwọ fun eyi ti o ni.” Ọba dahun wipe, “Rara, a nilati mu ileri wa ṣe.” Nitori naa, a sọ wipe a nilati gbọ ti ẹnu Alatunṣe naa.

Gbogbo ilu naa ni wọn fẹ lati ri ọkunrin pataki yii. Ọpọ awọn alejo ni wọn si rọ wa si ile rẹ. Ara Luther ṣẹṣẹ n ya bọ ni lati inu aisan ti o n ṣe e; irin ajo ti o rin fun ọsẹ meji gbako si ti jẹ ki o rẹ ẹ. O nilati mura silẹ fun iṣẹlẹ pataki ti yoo ṣẹlẹ ni ọjọ keji, nitori naa o nilo isinmi ati idakẹjẹ. Ṣugbọn ifẹ awọn eniyan lati ri pọ tobẹẹ gẹẹ ti o fi jẹ wipe akoko kekere ni o ni lati fi sinmi, nigba ti awọn ijoye, jagunjagun, alufa, ati awọn ọmọ ilu pejọ pọ yii ka. Ọpọ ninu awọn ijoye ti wọn fi igboya beere ki ọba o ṣe atunṣe si awọn aṣeju inu ijọ wa ninu awọn wọnyi, ti Luther si sọ wipe “gbogbo wọn ni wọn ti ri ominira nitori iyinrere mi.” Awọn ọrẹ ati ọta ni wọn wa lati wa wo alufa onigboya naa, ṣugbọn o tẹwọ gba wọn ni aimikan, o si da wọn lohun pẹlu ifọkanbalẹ ati ọgbọn. O duro gbọin pẹlu igboya. Oju rẹ ti o tinrin ti o si ru nitori wahala ati aisan, fi aanu ati ayọ han. Ọwọ ati itara ọrọ rẹ fun ni igboya ti awọn ọta rẹ ko le dojukọ. Ẹnu ya awọn ọta ati ọrẹ lapapọ. Awọn kan gbagbọ wipe ọwọ Ọlọrun wa pẹlu rẹ; awọn miran sọ bi awọn Farisi ti sọ nipa Jesu wipe: “O ni ẹmi eṣu.”

Ni ọjọ keji, a pe Luther wa siwaju igbimọ. Iranṣẹ ọba si mu wa si gbọngan ipade; sibẹ pẹlu wahala ni o fi debẹ. Awọn oluworan ti wọn fẹ wo alufa ti o gboya lati ṣe atako si aṣẹ popu kun ibi gbogbo.

Bi o ti fẹ de iwaju awọn adajọ, jagunjagun agba kan, ẹni ti o ti ṣẹgun ọpọlọpọ ogun fi aanu sọ fun wipe: “Ajẹjẹ ẹsin alailagbara, ajẹjẹ ẹsin alailagbara, iwọ yoo ṣe ipinu ti o niyi ju eyi ti emi tabi eyikeyi ninu awọn adari ogun ti ṣe ri ninu awọn ogun wa ti wọn gbona janjan lọ. Ṣugbọn bi ọna rẹ ba jẹ ododo, ti o si da ọ loju, tẹsiwaju ni orukọ Ọlọrun, maṣe bẹru ohunkohun. Ọlọrun ko ni fi ọ silẹ.”

Lẹyin-ọrẹyin, Luther duro niwaju igbimọ. Ọba gun ori itẹ rẹ. Awọn ti wọn ṣe pataki julọ ninu ijọba naa ni wọn yi ká. Ko si ẹni ti o tii fi ara han niwaju awujọ pataki nibi ti Martin Luther ti fẹ dahun si igbagbo rẹ yii ri. “Ifarahan yii funra rẹ jẹ ami iṣẹgun lori aṣẹ popu. Popu ti da ọkunrin naa lẹbi, o wa n fi ara han niwaju igbẹjọ, ti o jẹ wipe, nipa ṣiṣe eyi, o ti gbe ara rẹ ga ju popu lọ. Popu ti yọ kuro ninu ijọ, o si ti yọ kuro ninu awujọ awọn eniyan; sibẹ ede apọnle ni a fi pe e, ti o si

fi ara han niwaju igbimọ ti o ṣe pataki julọ ni agbaye. Popu ti sọ wipe ko gbọdọ sọrọ mọ titi lae, o wa fẹ sọrọ niwaju ọgọọrọ awọn eniyan ti wọn wá lati ilẹ jijina réré nibi ti wọn ti n ṣe ẹsin Kristẹni. Ayipada nla ni o ṣẹlẹ nipasẹ Luther. Romu ti n sọkalẹ kuro ni ori itẹ rẹ, ohùn ajẹjẹ ẹsin kan ni o si fa irẹsilẹ yii."

Niwaju igbimọ alagbara ti o si lorukọ yii, ẹru ba Luther, ẹni ti a kò bi ni ile ọlọrọ, ti o si dabi ẹnipe oju ti. Diẹ lara awọn ijoye ti wọn wo bi o ti ṣe, lọ ba wọn si sọ kẹlẹkẹlẹ si leti wipe: "Maṣe bẹru awọn ti wọn le pa ara ṣugbọn ti wọn ko le pa ọkan." Omiran sọ wipe: "Nigba ti a ba mu yin wa siwaju awọn alaṣẹ ati ọba nitori Mi, Ẹmi Baba yin yoo fun yin ni ohun ti ẹyin yoo wi." Bayi ni awọn eniyan nla aye ṣe fi ọrọ Ọlọrun fun iranṣẹ Rẹ ni okun ninu akoko idanwo rẹ.

A gbe Luther wa si ibi ti o ti doju kọ itẹ ọba gan. Gbogbo awọn ero inu awujọ naa dakẹ jẹẹ. Iranṣẹ ọba kan wa dide, o tọka si awọn iwe Luther, o beere ki Alatunṣe naa o dahun awọn ibeere meji—boya o gba wọn gẹgẹ bi tirẹ, ati boya o fẹ lati sẹ awọn ohun ti o kọ si inu wọn. Nigba ti a ti ka akọle awọn iwe naa, Luther dahun si ibeere akọkọ wipe ohun gba awọn iwe naa gẹgẹ bi ti oun. O sọ wipe, "Ni ti ekeji, niwọn igba ti o jẹ wipe ibeere naa ni i ṣe pẹlu igbagbọ ati igbala ọkan, ti o si kan ọrọ Ọlọrun, ohun ìní ti o ṣe iyebiye, ti o tobi julọ ni ọrun ati ni aye, maa wuwa omugọ bi mo ba dahun ni aironu. Mo le ma sọ to ohun ti o yẹ ki n sọ, tabi ki n sọ ju ohun ti otitọ nilo lọ, o sile jẹ ki n ṣe si ọrọ Kristi: 'Ẹnikẹni ti o ba sẹ Mi niwaju eniyan, òun naa ni Emi yoo sẹ niwaju Baba Mi ti n bẹ ni ọrun.'[Matiu 10:33.] Nitori idi eyi, mo fi gbogbo irẹlẹ bẹ ọba alayeluwa, ki o fun mi ni akoko, ki n baa le fesi lai ṣẹ si ọrọ Ọlọrun."

Luther wuwa pẹlu ọgbọn nipa bibẹ ẹbẹ yii. Iwa rẹ fi da gbogbo agbajọ naa loju wipe ki i ṣe igbonara tabi aironu ni o fi wuwa. Iru ifọkanbale ati ikora-ẹni-nijanu yii, ti a ko reti lati ọdọ ẹni ti o fi ara rẹ han gẹgẹ bi onigboya, ti ki i pa ohùn da fi kun agbara rẹ, o si ran an lọwọ lati fesi pẹlu ọgbọn, ipinu, òye, ati idara-ẹni-loju ti o ya awọn ọta rẹ lẹnu ti o si ja wọn kulẹ, ti o tun ṣe ibawi fun igberaga ati afojudi wọn.

Ni ọjọ keji, yoo fi ara han lati wa ṣe idahun ikẹyin. Fun igba diẹ, ọkan rẹ rẹwẹsi nigba ti o ronu lori awọn agbara ti wọn papọ tako otitọ. Igbagbọ rẹ mi; ibẹru ati iwariri ba, ipaya si bo o mọlẹ. Awọn ewu sọ ara wọn di pupọ niwaju rẹ; o dabi ẹnipe awọn ọta rẹ fẹ ṣẹgun, ti agbara okunkun si fẹ bori. Ikuuku bo o mọlẹ, o si dabi ẹnipe o fẹ pin niya kuro ni ọdọ Ọlọrun. O nilo idaniloju wipe Oluwa awọn ọmọ ogun yoo wa pẹlu oun. Ninu iporuuru ọkan rẹ, o dubulẹ o si kigbe awọn ẹdun ọkan rẹ sita, eyi ti ko lè yé ẹnikẹni ayafi Ọlọrun.

O bẹbẹ wipe: “Ọlọrun ayeraye alagbara, aye yii ti buru to! Kiyesi o la ẹnu rẹ lati gbemi mi, igbẹkẹle mi ninu rẹ si kéré. . . . Bi o ba jẹ wipe agbara aye yii nikan ni mo gbẹkẹle, gbogbo rẹ yoo dopin. . . . Akoko ikẹyin mi ti de, a ti ṣe idalẹbi mi. . . . Iwọ Ọlọrun ran mi lọwọ lati doju kọ gbogbo ọgbọn aye yii. Ṣe eyi, . . . Iwọ nikan ṣoṣo; . . . nitori iṣẹ yii ki i ṣe temi bikoṣe tirẹ. Emi ko ni ohunkohun lati ṣe nihin, ko si ohun ti mo le ja fun pẹlu awọn eniyan nla aye yii. . . . Ṣugbọn Iwọ ni O ni iṣẹ naa, . . . iṣẹ ododo ati iṣẹ ayeraye ni. Oluwa ran mi lọwọ! Ọlọrun olododo ti ki i yi pada, emi ko gbe igbẹkẹle mi sinu eniyan kankan. . . . Ohun gbogbo ti o jẹ ti eniyan ko daju; ohun gbogbo ti o ti ọdọ eniyan wa n baku. . . . Iwọ ti yan mi fun iṣẹ yii. . . . Duro ni ẹgbẹ mi, nitori Ayanfẹ Rẹ Jesu Kristi, Ẹni ti i ṣe aabo, asa, ati ile iṣọ agbara mi.”

Agbara Ọlọrun ọlọgbọn julọ ni o jẹ ki Luther o mọ inu ewu ti o wa, ki o ma baa gbẹkẹle agbara rẹ, ki o si yara fi aigbọn sare wọ inu ewu lọ. Sibẹ ki i ṣe ibẹru ijiya ara rẹ, tabi ibẹru ijiya, tabi iku, ti o dabi ẹni pe o de tan ni o ko ipaya ba. O ti wọ inu wahala naa, o si ri wipe oun ko kun oju oṣuwọn lati pade rẹ. Adanu le ba iṣẹ otitọ nitori ibaku rẹ. Ko ba Ọlọrun jijakadi nitori aabo ara rẹ, bikoṣe nitori iṣẹgun iyinrere. Bii Israeli, ni aṣalẹ ijakadi ni ẹba odo naa, bẹẹ ni idamu ati ibanujẹ ọkan rẹ ti ri. Bi Israeli, o si ṣẹgun pẹlu Ọlọrun. Ninu ipo ainiranlọwọ rẹ, igbagbọ rẹ di Kristi, Oludande rẹ alagbara mu. A fun ni okun pẹlu idaniloju wipe ko ni fi ara han niwaju igbimọ ni ohun nikan. Alaafia pada si ọkan rẹ, inu rẹ si dun nitori pe a fun ni anfani lati gbe ọrọ Ọlọrun ga niwaju awọn alaṣẹ orilẹ ede.

Pẹlu ọkan rẹ ti o duro si ọdọ Ọlọrun, Luther mura silẹ fun wahala ti o wa niwaju rẹ. O ronu lori bi oun yoo ti fesi, o yẹ awọn abala inu iwe rẹ wo, o si wa awọn ẹsẹ ti wọn yẹ lati inu Iwe Mimọ lati fi gbe ara rẹ lẹsẹ. O wa gbe ọwọ alaafia rẹ le ori Iwe Mimọ ti o ṣi silẹ niwaju rẹ, o si gbe ọwọ ọtun rẹ si oke ọrun, o jẹjẹ “lati jẹ olooto si iyinrere, ati lati ṣe ijẹwọ igbagbọ rẹ laisi idiwọ, ani bi yoo ba tilẹ fi ẹjẹ rẹ ṣe edidi si ijẹri rẹ.”

Nigba ti a da pada siwaju igbimọ, oju rẹ ko fi ibẹru tabi itiju han. Ọkan rẹ balẹ, o si wa ni alaafia, sibẹ o ni igboya, o si duro pẹlu iyì, o duro gẹgẹ bi ẹlẹri Ọlọrun laarin awọn ẹni nla aye. Iranṣẹ ọba tun wa beere lọwọ rẹ boya o fẹ lati yi awọn ikọni rẹ pada. Luther dahun pẹlu ohùn jẹjẹ, laipariwo, laisi igbonara tabi irunu. Iṣesi rẹ ni ibọwọ fun, bẹẹ ni ko jọ ara rẹ loju; sibẹ o fi igboya ati ayọ ti o jọ apejọpọ naa loju han.

Luther sọ wipe, “Ọba oniwatutu julọ, ẹyin ijoye ti o gbayi, ati ẹyin oluwa oloore ọfẹ, mo fi ara han niwaju yin loni ni ibamu pẹlu aṣẹ ti ẹ fi fun mi lana, mo si rọ kabiyesi ati ẹyin eniyan pataki pẹlu oore ọfẹ

Ọlọrun lati fi pẹlẹkutu tẹti si awijare si ohun ti emi gbagbọ wipe o jẹ ododo ati otitọ. Bi mo ba tasẹ agẹrẹ si ilana iwuwasi ni aafin nipa aimọkan, mo rọ yin lati fi ori ji mi; nitori pe a ko tọ mi dagba ni aafin ọba bikoṣe ni ile awọn ajẹjẹ ẹsin."

Lẹyin eyi, o wa tẹsiwaju lati dahun ibeere ti a bí; o sọ wipe awọn iwe wọnyi ko jẹ ohun kan naa. Ninu awọn kan, o sọ nipa igbagbọ ati iṣẹ rere, ani awọn ọta rẹ sọ wipe wọn ko lewu, ṣugbọn wọn dara. Lati yi awọn nnkan wọnyi pada yoo jasi titako otitọ ti gbogbo eniyan fi ọwọ si. Awọn keji ní awọn ikọni ti wọn ṣe afihan awọn iwa ibajẹ ati aṣeju ilana popu ninu. Lati yi awọn wọnyi pada yoo tumọ si fifun iwa onroro Romu lokun ti yoo si ṣi ilẹkun silẹ si fun ọpọlọpọ awọn iwa aitọ miran. Ninu awọn isọri iwe rẹ kẹta, o tako awọn eniyan ti wọn wi awijare nipa awọn iwa ibi wọnyi. Nipa awọn wọnyi, o sọ wipe oun ti wu iwa ipa ju bi o ti yẹ lọ. Ko sọ wipe oun ko ni aṣiṣe rárá; ṣugbọn oun ko le sẹ awọn iwe wọnyi paapa, nitori ṣiṣe bẹẹ yoo ki awọn ọta otitọ laya, wọn yoo si ri anfani lati fi iya jẹ awọn eniyan Ọlọrun si.

O tẹsiwaju wipe, "Sibẹ eniyan ni mi, mi ki i ṣe Ọlọrun; maa wa wi awijare nipa ara mi gẹgẹ bi Kristi ti ṣe: Bi mo ba ti sọ ohun buburu, tabi ti mo jẹri si ohun buburu, mo rọ ọba oniwatutu julọ ati gbogbo ẹyin ijoye ọlọla ati gbogbo ẹyin eniyan pẹlu aanu Ọlọrun lati fihan lati inu awọn akọsile awọn woli ati apostoli ibi ti mo ti ṣe aṣiṣe. Ni kete ti mo ba ti ri eyi, maa kọ gbogbo aṣiṣe silẹ, n o si jẹ ẹni akọkọ ti yoo ko awọn iwe wọnyi, ti n o si da wọn sinu ina.

"Mo ni ireti wipe ohun ti mo sẹsẹ sọ tan yii fihan wipe mo ti gbe awọn ewu ti mo fi ara mi si yẹwo finifini; ṣugbọn dipo ki aya o fo mi, inu mi dun ni nitori pe, bii ti igba iṣaaju, iyinrere di okunfa wahala ati iyapa, gẹgẹ bi a ti ri loni yii. Bi ọrọ Ọlọrun ati atubọtan rẹ ti ri niyii. 'Mo wa, ki i ṣe lati ran alaafia wa si aye, bikoṣe ida' ni Jesu Kristi wi. Ọlọrun jẹ oniyanu, O si ni ẹru ninu imọran Rẹ; ẹ ṣọra nitori nipa rírò lati pa ina iṣọtẹ, ki ẹ ma baa ṣe inunibini si ọrọ mimọ Ọlọrun, ki ẹ ma si ṣe ko idamu wahala ti ẹ ko le bori, ni ajalu ti isinsinyi, ati iparun ayeraye si ori ara yin. . . . Mo le sọ ọpọlọpọ apẹẹrẹ lati inu ọrọ Ọlọrun. Mo le sọ nipa Farao, awọn ọba Babiloni, ati ti Israeli, ti iṣe wọn ko pakún iparun wọn to igba ti wọn ba n ṣe imọran, ti o dabi ẹnipe oun ni o dara ju lati fi idi ijọba wọn mulẹ. 'Ọlọrun n ṣi oke ni idi, wọn ko si mọ bẹẹ.'"

Luther ti sọrọ ni ede Germany, a wa sọ wipe ki o sọ ohun kan naa ni ede Latin. Bi o tilẹ jẹ wipe o ti rẹ ẹ nitori akitiyan rẹ ni akọkọ, o gba si wọn lẹnu, o tun sọ ọrọ rẹ ni ọna ti o da ṣaka, ati pẹlu agbara bi i ti akọkọ. Agbara Ọlọrun ṣiṣe ninu ọrọ yii. Èké ati aimọkan ti fọ ọpọlọpọ

awọn ijoye niye ti o fi jẹ wipe wọn ko ri oye iṣọwọronu rẹ ninu ọrọ rẹ akọkọ; ṣugbọn atunsọ rẹ ran wọn lọwọ lati ri ohun ti o n sọ daradara.

Awọn ti wọn mọọmọ di oju wọn si otitọ, ti wọn si ti pinu lati maṣe jẹ ki otitọ o yé wọn, binu si agbara ọrọ Luther. Bi o ti dakẹ ọrọ sisọ, abẹnugan inu igbimọ naa fi ibinu sọ wipe: “O koi ti i dahun ibeere ti a bi ọ. . . . O nilati dahun ni ọna ti o yeni yekeyeke. . . . Ṣe wa a yi ọrọ rẹ pada, tabi o ò ni yi pada?”

Alatunṣe naa dahun wipe: “Niwọn igba ti kabiyesi ọlọwọ julọ ati ẹyin ọlọla julọ fẹ ki n dahun ni ṣoki, ni ọna ti o yeni yekeyeke, maa fun yin ni ọkan, ohun naa si ni eyi: Emi ko lè jọwọ igbagbọ mi le popu tabi igbimọ lọwọ, nitori ti o han kedere wipe ni ọpọ igba wọn maa n ṣe aṣiṣe, wọn si maa n tako ara wọn. Ayafi bi mo ba ri oye rẹ lati inu ẹri Iwe Mimọ, tabi pẹlu ironu ti o da ṣaka, ayafi bi awọn ayọka ti mo ka ba fi yemi, ati ayafi bi wọn ba so ẹri ọkan mi pọ mọ ọrọ Ọlọrun, n ko le, bẹẹ ni n ko ni yi ọrọ mi pada, nitori o lewu fun Kristẹni lati sọrọ tako ẹri ọkan rẹ. Eyi ni ipinu mi, n ko le ṣe ohun miran mọ; ki Ọlọrun ran mi lọwọ. Amin.”

Bayi ni ọkunrin olododo yii ṣe duro lori ipilẹ ti o daju ti ọrọ Ọlọrun. Imọle ọrun tan si oju rẹ. Gbogbo wọn ni wọn ri bi o ti tobi to ati iwa mimọ rẹ, alaafia ati ayọ ọkan rẹ bi o ti n jẹri ni atako si agbara èké, ti wọn si jẹri si bi igbagbọ ti o bori aye ti jẹ alagbara tó.

Fun igba diẹ, iyalẹnu ko le jẹ ki gbogbo agbajọ naa o sọrọ. Nigba ti o kọkọ n fesi, Luther sọrọ pẹlu ohun jẹẹjẹ, ati pẹlu ibọwọ fun ti o fẹ jọ wipe o ti n juwọ silẹ. Awọn ẹlẹsin Romu tumọ eyi si ẹri wipe igboya rẹ ti n baku. Wọn ri ẹbẹ fun akoko gẹgẹ bi imura rẹ lati yi ohun pada. Charles funra rẹ, nigba ti o wo irisi ajẹjẹ ẹsin naa, aṣọ talaka rẹ, ati isọrọ ṣakala rẹ, o sọ pẹlu ẹgan wipe: “Ajẹjẹ ẹsin yii ko le sọ mi di ẹlẹkọ odi laelae.” Igboya ati iduroṣinṣin ti o wa fihan nisinsinyii, pẹlu agbara ironu rẹ ti o da ṣaka, ya gbogbo wọn lẹnu. Ọba naa sọ pẹlu idunnu wipe: “Ajẹjẹ ẹsin naa sọrọ pẹlu ọkan líle, ati igboya tí kò mi.” Ọpọlọpọ awọn ijoye Germany fi iwuri ati ayọ wo aṣoju orilẹ ede wọn yii.

A ṣẹgun awọn atẹle Romu; iṣẹ wọn fi ara han ni ọna ti o buru julọ. Wọn wọna lati fi idi agbara wọn mulẹ, ki i ṣe nipa lilo Iwe Mimọ, bikoṣe nipa hihalẹ, iṣọwọsọrọ Romu ti ki i baku. Abẹnugan igbimọ naa sọ wipe: “Bi o ò ba ni yi ọrọ rẹ pada, ọba ati awọn ipinlẹ inu ijọba yii yoo ro nipa ohun ti wọn yoo ṣe si ẹlẹkọ odi ti ko le yipada.”

Awọn ọrẹ Luther ti wọn fi ayọ nla tẹti si ọrọ rẹ wariri nitori ọrọ wọnyi; ṣugbọn ọmọwe naa sọ pẹlu ifọkanbalẹ wipe: “Ki Ọlọrun o jẹ oluranlọwọ mi, nitori pe n ko le yi ohunkohun pada.”

A sọ wipe ki o kuro ninu igbimọ naa, nigba ti awọn ijoye n jiroro papọ. Awọn eniyan naa mọ wipe wahala nla naa ti de. Bi Luther ti kọ

jalẹ lati yipada lè yí itan ijọ pada fun ọpọlọpọ ọdun. A wa pinu lati fun ni anfani kan si lati yipada. Fun igba ikẹyin, a mu wa sinu igbimọ naa. A tun bi i leere lẹẹkan si boya yoo yi awọn ikọni rẹ pada, tabi ko ni yi wọn pada. O sọ wipe, "Emi ko ni esi miran lati fọ ju eyi ti mo ti fọ tẹlẹ lọ." O han gbangba wipe a ko le rọ ọ lati tẹriba fun aṣẹ Romu, boya pẹlu awọn ileri, tabi ihalẹ.

Inu bi adari ijọ paadi wipe ajẹjẹ ẹsin lasan yii le ṣe bayii kẹgan agbara ti o ti n mu ki awọn ọba ati ijoye o wariri; wọn fẹ ki o ri ibinu wọn nipa fifi iya jẹ ẹ titi ti yoo fi ku. Ṣugbọn Luther, nigba ti o mọ ewu to le wu oun, ba gbogbo awọn Kristẹni sọrọ tọwọtọwọ ati pẹlu idaniloju. Ọrọ rẹ ko ni igberaga, igbonara, tabi ṣiṣe afihan ni ọna ti ko tọ. Ko ri ara rẹ tabi awọn eniyan nla ti wọn yi ka, ṣugbọn o ni imọlara wipe oun wa niwaju Ẹni ti O fi ohun gbogbo ju popu, awọn alufa agba, awọn ọba, ati awọn alaṣẹ ijọba lọ. Kristi sọrọ nipasẹ ẹri Luther pẹlu agbara ati ọlanla ti o ya awọn ọta ati ọrẹ rẹ lẹnu ni asiko naa. Ẹmi Ọlọrun wa ninu igbimọ naa, O n ba ọkan awọn ijoye ijọba naa sọrọ. Ọpọ awọn ijoye naa ni wọn fi igboya sọ wipe iṣẹ Luther tọna. Ọpọ ni wọn gbagbọ ninu otitọ naa; ṣugbọn imọlara yii ko pẹ ninu awọn kan. Awọn miran si wa ti ko fi igbagbọ wọn han ni akoko naa, ṣugbọn nigba ti wọn funra wọn yẹ Iwe Mimọ wò ni igba ti o yá, wòn fi igboya ran iṣẹ Atunṣe lọwọ.

Afọbajẹ Frederick ti n wọna bi Luther yoo ti fi ara han niwaju igbimọ, o si fi gbogbo ara tẹti silẹ si ọrọ rẹ. O fi ayọ ati iwuri wo igboya, iduroṣinṣin, ikora-ẹni-nijanu, ati ipinu ọmọwe naa lati duro ṣinṣin si ninu awijare rẹ. O fi eyi wé awọn ẹgbẹ keji, o si ri wipe agbara otitọ ti sọ ọgbọn awọn popu, ọba, ati awọn alufa agba di asan. Agbara ijọ padi ri ibaku ti a yoo mọ laarin gbogbo awọn orilẹ ede, ati ni awọn akoko ti n bọ.

Bi aṣoju naa ti ri ipa ọrọ Luther, o bẹru fun aabo agbara Romu ju ti atẹyinwa lọ, o si pinu lati lo ohun gbogbo ti o wa ni ikawọ rẹ lati bi Alatunse naa ṣubu. Pẹlu gbogbo ọgbọn isọrọ ati oṣelu eyi ti a mọ ọ mọ, o fihan ọba ọdọ naa bi o ti jẹ iwa omugọ tó ati ewu ti o wa ninu ṣiṣe ainani ibadọrẹ ati iranlọwọ agbara Romu nitori ajẹjẹ ẹsin kan lasan.

Awọn ọrọ rẹ ni ipa ti wọn. Ni ọjọ keji ti Luther fesi, Charles jẹ ki a ka iṣẹ iranṣẹ kan si igbimọ naa ti o kede ipinu rẹ lati tẹsiwaju ninu ipinu awọn ti wọn ti jẹ ṣaaju rẹ, lati ṣe iranwọ fun, ati lati daabo bo ẹsin Katoliki. Niwọn igba ti Luther ti kọ lati kọ awọn aṣiṣe rẹ silẹ, a yoo ṣe atako rẹ, ati awọn ẹkọ odi rẹ ni ọna ti o lagbara. "Ajẹjẹ ẹsin kan ṣoṣo, ti iwa omugọ rẹ ṣi lọna, ti dide lati tako igbagbọ ẹsin Kristẹni. Maa fi ijọba mi, ohun ini mi, awọn ọrẹ mi, ara mi, ẹjẹ mi, ọkan mi, ati

ẹmi mi ṣofo lati le dawọ iru iwa aiwabọlọrun yii duro. Mo ṣetan lati kọ Augustine Luther silẹ, lati fi ofin de e lati maṣe da wahala silẹ bi o ti wu ki o kéré mọ laarin awọn eniyan; ma a tun tako òun ati awọn atẹle rẹ gẹgẹ bi ẹlẹkọ odi alaigbọran, nipa lile wọn kuro ninu ijọ, lile wọn kuro ninu ilu, ati pẹlu ohun gbogbo ti yoo pa wọn run. Mo pe gbogbo awọn ara ilu lati wuwa bi Kristẹni tootọ." Ṣugbọn ọba naa sọ wipe a nilati bọwọ fun iwe idaabobo Luther, ati pe ṣaaju ki a to ṣe ohunkohun si, a nilati jẹ ki o de ile rẹ ni alaafia.

Ero meji ni o gbilẹ kan laarin awọn ọmọ igbimọ. Awọn aṣoju popu fẹ ki a ma bọwọ fun iwe idaabobo rẹ. Wọn sọ wipe, "O yẹ ki odò Rhine o gba eeru rẹ, gẹgẹ bi o ti ṣe gba ti John Huss ni ọgọrun ọdun seyin." Ṣugbọn awọn ijoye Germany, bi o tilẹ jẹ wipe awọn funra wọn jẹ ọmọ ijọ paadi ati ọta Luther, wọn tako iru aika ẹjẹ si yii gẹgẹ bi abawọn ni ara ọla orilẹ ede wọn. Wọn tọka si awọn rogbodiyan ti wọn ṣẹlẹ lẹyin iku Huss, wọn si sọ wipe, wọn ko le jẹ ki iru awọn iṣẹlẹ buburu yii o tun ṣẹlẹ si Germany, tabi si ọba wọn ti o jẹ ọdọ.

Charles funra rẹ dahun si ibeere alailojuti yii wipe: "Bi a ba tilẹ le iṣotitọ ati iṣododo kuro ninu aye, o yẹ ki wọn ri ibi aabo ninu ọkan awọn ijoye." Awọn ọta Luther tun rọ ọ lati ṣe si Alatunṣe naa gẹgẹ bi Sigismund ti ṣe si Huss—ki o fi i silẹ si ikawọ ijọ; ṣugbọn nigba ti o ranti bi Huss ti na ọwọ rẹ si ẹwọn ti a fi de e, ti o si ran ọba naa leti nipa ileri rẹ ti a kò kà sí niwaju gbogbo eniyan, Charles V sọ wipe: "Oju ko gbọdọ ti mi bii ti Sigismund.

Sibẹ Charles mọọmọ kọ otitọ ti Luther sọ silẹ. Ọba naa kọwe wipe, "Mo ti ṣe ipinu atọkanwa lati tẹle apẹẹrẹ awọn baba nla mi." O ti pinu wipe oun ko ni yẹsẹ kuro ni oju ọna aṣa, bi o ba tilẹ jẹ lati rin ni ọna otitọ ati ododo. Nitori pe awọn baba rẹ ṣe bẹẹ, oun yoo tẹle ilana popu, pẹlu gbogbo iwa ika ati iwa ibajẹ rẹ. Bi o ṣe ṣe ipinu rẹ niyi, ti o kọ lati gba imọlẹ miran ni afikun si eyi ti awọn baba rẹ gba, tabi lati ṣe iṣẹ ti wọn kò ṣe.

Ọpọlọpọ wa loni ti wọn dirọ mọ aṣa ati ikọni awọn baba wọn. Nigba ti Ọlọrun ba ran imọlẹ miran si wọn, wọn kọ lati gba a nitori, niwọn igba ti a ko ti fifun awọn baba wọn, wọn ko nilati gba a. A ko fi wa si ipo ti awọn baba wa wà; nitori naa, ojuṣe ati iṣẹ wa ko ri bakan naa pẹlu ti wọn. Ọlọrun ko ni fi ọwọ si bi a ba n wo apẹẹrẹ awọn baba wa lati mọ ojuṣe wa dipo ki a wa ọrọ otitọ funra wa. Ojuṣe wa tobi ju ti awọn baba nla wa lọ. A yoo jiyin fun imọlẹ ti wọn gba, ti a fi le wa lọwọ gẹgẹ bi ajogunba, bẹẹ ni a yoo jiyin fun imọlẹ tuntun ti o n tan si wa lati inu ọrọ Ọlọrun nisinsinyii.

Kristi sọ fun awọn Ju alaigbagbọ wipe: "Bi n ko ba wa lati wa ba wọn sọrọ, wọn ki ba ti ni ẹṣẹ: ṣugbọn nisinsinyii, wọn di alairiwi fun

ẹṣẹ wọn." Johanu 15:22. Agbara Ọlọrun kan naa ni o ti ipa Luther sọrọ si ọba ati awọn ijoye Germany. Bi imọlẹ naa si ti n tàn lati inu ọrọ Ọlọrun, Ẹmi Rẹ bẹbẹ pẹlu ọpọlọpọ ninu apero naa fun igba ikẹyin. Bi Pilatu ti jẹ ki igberaga ati ifẹ eniyan o sé ọkan oun mọ Olurapada aye ni ọpọ ọdun sẹyin; bi Felix nigba ti o n wariri, ti sọ fun iranṣẹ otitọ naa wipe, "Maa lọ ná; nigba ti o ba wọ fun mi, maa ranṣẹ si ọ;" bi ọba Agrippa onigberaga ti jẹwọ wipe, "O fẹrẹ sọ mi di Kristẹni tan" (Iṣe 24:25; 26:28); sibẹ ti o yi kuro ninu iṣẹ iranṣẹ ti a ran lati ọrun—bẹẹ gẹgẹ ni Charles V, ni titẹle igberaga ati ilana aye, ṣe pinu lati kọ imọlẹ otitọ silẹ.

Iroyin nipa ohun ti wọn yoo ṣe si Luther ti tan kalẹ, o si ti fa irọkẹkẹ ni gbogbo ilu naa. Alatunṣe naa ti ni ọpọlọpọ ọrẹ, ti wọn mọ iwa ẹtan ati iwa ika ti Romu maa n wu si ẹnikẹni ti o ba gboya lati tu aṣiri awọn iwa ibajẹ rẹ, wọn pinu wipe a ko gbọdọ ta ẹjẹ rẹ silẹ. Ọgọrọ awọn ijoye ni wọn pinu lati daabo bo o. Ki i ṣe awọn perete ni wọn bu ẹnu atẹ lu iṣẹ iranṣẹ ọba wipe o fi itẹriba lọna ailagbara han si aṣẹ Romu. A lẹ orişirişi awọn akọle mọ ara ilẹkun ile ati ni ojutaye, awọn kan ba Luther wi, ti awọn miran si ti i lẹyin. A kọ ọrọ ti o ni itumọ lati inu ọrọ ọlọgbọn ni sinu ọkan ninu wọn bayii wipe: "Ègbé ni fun ọ, ilẹ naa, ti ọba rẹ jẹ ọmọde." Oniwasu 10:16. Ifẹ ti wọn ni si Luther ni gbogbo Germany pọ to bẹẹ gẹẹ ti o fi da ọba ati awọn ọmọ igbimọ loju wipe bi wọn ba wu iwa aişootọ kan si, yoo pa alaafia ijọba, ati itẹ ọba lara.

Frederick ti Saxony mọọmọ ma fi ero rẹ nipa Alatunṣe naa han sita, ṣugbọn o n ṣọ lọwọ lẹṣẹ, o n wo gbogbo irinsi rẹ ati ti awọn ọta rẹ. Ṣugbọn awọn kan wa ti wọn ko janpata lati fi ikaanu wọn fun Luther pamọ. Awọn ijoye, awọn ọlọrọ ati alaṣẹ, ati awọn eniyan pataki miran, ninu ijọ ati ninu ilu. Spalatin kọwe wipe, "Yàrá ọmọwe naa ko le gba gbogbo awọn alejo ti wọn wa." Awọn eniyan wo o afi bi ẹnipe ki i ṣe eniyan lasan. Ani awọn ti wọn ko gbagbọ ninu awọn ikọni rẹ ko le ṣe aifi ifẹ wọn han si iduroşinşin rẹ ti o fun ni igboya lati doju kọ iku dipo ki o tako ẹri ọkan rẹ.

A ṣe akitiyan lọpọlọpọ lati ri wipe Alatunṣe naa ba Romu laja. Awọn ijoye ati alaṣẹ ṣe alaye fun wipe bi o ba tẹsiwaju lati gbe ipinu rẹ ga ni atako si ti ijọ ati ti igbimọ, a yoo le kuro ninu ijọba naa laipẹ, ko si ni ni aabo. Luther fesi si ọrọ yii wipe: "A ko le waasu iyinrere Kristi laini ọta. . . . Bawo ni ibẹru ewu ti n bọ yoo ṣe ya mi kuro ni ọdọ Oluwa, ati ọrọ mimọ ni, ti i ṣe wipe oun nikan ṣoṣo ni otitọ? Rara; mo yan lati fi ara, ẹjẹ, ati ẹmi mi lelẹ."

A tun rọ ọ lati gba idajọ ọba, ki yoo si ni ohun kan lati bẹru. O dahun wipe, "Pẹlu gbogbo ọkan mi, mo faramọ ki ọba, awọn ijoye, ani eyi ti o kere julọ ninu ẹsin Kristẹni o yẹ awọn iṣẹ mi wo, ki o si ṣe

idajọ le wọn lori; ṣugbọn lori ohun kan ni, ki wọn lo ọrọ Ọlọrun gẹgẹ bi odiwọn wọn. Eniyan ko ni ohunkohun lati ṣe ju ki o ṣe igbọran si lọ. Ẹ maṣe wuwa ipa si ọkan mi, eyi ti a ti so papọ mọ Iwe Mimọ.”

O dahun si ipẹ miran wipe: “Mo gba lati kọ iwe idaabobo mi silẹ. Mo fi ara mi ati ẹmi mi si ọwọ ọba, ṣugbọn ọrọ Ọlọrun—láyé!” O sọ ifẹ rẹ lati gba ipinu igbimọ apapọ lori ohun kan, ki igbimọ o ṣe ipinu rẹ ni ibamu pẹlu Iwe Mimọ. O fikun wipe, “Ninu ohun ti o ni i ṣe pẹlu ọrọ Ọlọrun ati igbagbọ, gbogbo Kristẹni ni wọn le ṣe idajọ gẹgẹ bi popu ti le ṣe, bi ẹgbẹgbẹrun igbimọ ba tilẹ ti i lẹyin.” Lẹyin-ọrẹyin, awọn ọta ati awọn ọrẹ rẹ gba wipe asan ni yoo jasi bi wọn ba tubọ n rọ ọ lati ba Romu laja.

Bi o ba ṣe wipe Alatunṣe naa yẹsẹ ninu gbolohun ọrọ kan ṣoṣo ni, Satani ati awọn ọmọ ogun rẹ i ba ṣẹgun. Ṣugbọn iduroṣinṣin rẹ laiyẹsẹ ni a lo fun itusilẹ ijọ, ati ibẹrẹ igba ọtun ti o dara. Ipa ọkunrin kan ṣoṣo yii, ti o gboya lati ronu ati lati wuwa funra rẹ lori ọrọ ẹsin, yoo nipa lori ijọ ati araye, ki i ṣe ni akoko tirẹ nikan, ṣugbọn titi de ọjọ iwaju. Iduroṣinṣin rẹ ati iṣotitọ rẹ yoo fun gbogbo ẹni ti yoo ba la iru iriri kan naa kọja lokun, titi de opin aye. Agbara ati ọla Ọlọrun ga ju imọran eniyan lọ, o ga ju agbara nla Satani lọ.

Laipe, ọba paṣẹ ki Luther o pada sile, o si mọ wipe idalẹbi oun yoo tẹle aṣẹ yii kankan. Ikuuku ẹlẹru bo oju ọna rẹ; ṣugbọn bi o ti n kuro ni Worms, ọkan rẹ kun fun ayọ ati iyin. O sọ wipe, “Eṣu funra rẹ sọ ile agbara popu; ṣugbọn Kristi da alafo nla si inu rẹ, o si pọn dandan fun Satani lati ṣe ijẹwọ wipe Oluwa ni agbara ju oun lọ.”

Lẹyin ti o kuro, nitori pe ko fẹ ki a tumọ iduroṣinṣin oun si iṣọtẹ, Luther kọwe si ọba. O sọ wipe, “Ọlọrun ti o n yẹ ọkan wo ni ẹlẹri mi wipe mo ṣetan lati fi tọkantọkan ṣe igbọran si ọlanla rẹ, ninu ọwọ ati ailọwọ, ninu iye tabi iku, laifi ohunkohun silẹ, ayafi ọrọ Ọlọrun, nipa eyi ti eniyan n wa laaye. Ninu gbogbo ọrọ aye yii, iṣotitọ mi ko ni yẹ, nitori boya a jere tabi a padanu nihin ko ni itumọ si igbala. Ṣugbọn nigba ti o ba ni i ṣe pẹlu iye ainipẹkun, Ọlọrun ko fẹ ki eniyan o tẹriba fun eniyan. Nitori iru itẹriba yii ninu ọrọ ẹmi ni ijọsin tootọ, eyi ti o yẹ ki a fifun Ẹlẹda nikan ṣoṣo.”

Bi a ti ṣe gba Luther nigba ti o n kuro ni Worms tun larinrin ju igba ti o lọ sibẹ lọ. Awọn ijoye ijọ tẹwọ gba ajẹjẹ ẹsin ti a ti le kuro ninu ijọ naa, awọn alaṣẹ ilu si tẹwọ gba ẹni ti ọba ti da lẹbi. A pe e ki o wa waasu, bi o tilẹ jẹ wipe ọba ti sọ wipe ki o ma waasu, o tun gun ori pẹpẹ iwaasu. O sọ wipe, “Mi o jẹjẹ lati fi ẹwọn de ọrọ Ọlọrun, bẹẹ ni mi o ni jẹ iru ẹjẹ yii.”

Ko pẹ ti o kuro ni Worms ti awọn atẹle popu fi jẹ ki ọba o fi ofin de e. Ninu aṣẹ yii, a pe Luther ni “Satani funra rẹ ninu irisi eniyan, ti o wọ

aṣọ ajẹjẹ ẹsin.” A paṣẹ wipe ni kete ti agbara iwe idaabobo rẹ ba ti tan, ohun gbogbo ti a ba ri ni ki a lo lati da iṣẹ rẹ duro. A ṣọ wipe ẹnikẹni ko gbọdọ gba a sile, tabi fun ni ounjẹ tabi omi, a ko gbọdọ ran an lọwọ tabi ti i lẹyin ninu ọrọ tabi iṣe, ni ita gbangba tabi ninu ile. A nilati fi ipa mu nibikibi ti o ba wa, ki a si fi le awọn alaṣẹ lọwọ. Bakan naa, ki a fi awọn atẹle rẹ si atimọle, ki a si fi ipa gba ohun ini wọn. Ki a pa awọn iwe rẹ run, ati pe aṣẹ yii yoo ni agbara lori ẹnikẹni ti o ba tako o.

Afọbajẹ ti Saxony ati awọn ijoye ti wọn fẹran Luther ti kuro ni Worms ni kete ti o kuro nibẹ, awọn ọmọ igbimọ si fi ọwọ si aṣẹ ọba. Inu awọn ẹlẹsin Romu wa dun nisinsinyii. Wọn ro wipe opin ti de ba iṣẹ Atunṣe.

Ọlọrun ti pese ọna abayọ fun iranṣẹ Rẹ ninu akoko ewu yii. Ẹṣọ kan n wo gbogbo irin Luther, awọn ọkan tootọ ti wọn ni iyin si ti pinu lati daabo bo o. O ti han gedegbe wipe iku rẹ nikan ni o le tẹ Romu lorun; nipa pipa a mọ nikan si ni a fi le mu kuro lẹnu kiniun. Ọlọrun fun Frederick ti Saxony ni ọgbọn lati pete bi a o ti ṣe pa Alatunṣe naa mọ. A mu ero afọbajẹ naa ṣe pẹlu ifọwọsowọpọ awọn ọrẹ tootọ, a si gbe Luther pamọ kuro ni ọdọ awọn ọrẹ ati ọta. A mu nigba ti o n lọ sile, a gba a kuro lọdọ awọn ọrẹ rẹ, a si yara gbe gba inu igbo kan lọ si ile iṣọ ti o wa ni Wartburg, ile iṣọ ti o danikan wa ni ori oke. Bi a ti mu, ati ibi ti a gbe si ṣe ajeji to bẹẹ gẹẹ ti Frederick funra rẹ ko mọ ibi ti a gbe pamọ si fun igba pipẹ. Idi si wa fun aimọkan yii; niwọn igba ti afọbajẹ naa ko ba mọ ohunkohun nipa ibi ti Luther wa, ko le sọ ohunkohun nipa rẹ. O tẹ lọrun wipe Alatunṣe naa wa nibi aabo, imọ yii si fi ọkan rẹ balẹ.

Ọdun yipo tan, Luther si wa ni ipamọ. Inu Aleander ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ dun wipe ina iyinrere ti fẹrẹ ku. Ṣugbọn dipo eyi, Alatunṣe naa n fikun imọlẹ rẹ lati inu ile iṣura otitọ; imọlẹ rẹ yoo si tan pẹlu itansan ti o pọ si.

Ni ibi aabo rẹ ni Wartburg, inu Luther dun fun igba diẹ wipe oun bọ kuro ninu ina ati wahala ogun. Ṣugbọn laipẹ, idakẹjẹ ati isinmi ko fun ni ifọkanbalẹ mọ. Igbesi aye wahala ati idamu ti mọ lara, ko le fi ara da a mọ laiṣiṣe. Ni awọn ọjọ ti o danikanwa yii, o wo ipo ijọ, o si kigbe pẹlu iporuuru ọkan wipe: “O maṣe o! Ko si ẹnikan ni akoko ikẹyin ibinu rẹ, lati duro bi ogiri niwaju Oluwa, ki o si gba Israeli la!” O tun ro nipa ara rẹ, o wa bẹru ki a ma baa pe e ni ojo nitori pe o kuro ni oju ija. O wa ba ara rẹ wi nitori iwa ọlẹ rẹ, ati bi o ṣe n tẹ ara rẹ lorun. Sibẹ o n ṣe iṣẹ ti o dabi ẹnipe o pọ ju ẹnikan lati ṣe lọ lojoojumọ. Nigba ti awọn ọta rẹ n dun ara wọn ninu wipe a ti pa a lẹnu mọ, iyalẹnu ati idarudapọ ba wọn nigba ti wọn mọ daju wipe o si n ṣiṣẹ. A pin awọn iwe ilewọ pupọ ti o kọ kaakiri ilẹ Germany. O

tun ṣe iṣẹ ti o dara julọ fun awọn ara ilu rẹ nipa ṣiṣe itumọ Majẹmu Tuntun ni ede ilẹ Germany. Lati ilẹ olokuta Patmos rẹ, fun bi ọdun kan o tẹsiwaju lati maa waasu iyinrere ati lati maa ṣe ibawi ẹṣẹ ati awọn aṣiṣe akoko naa.

Ki i ṣe lati pa ẹmi Luther mọ kuro ni ọwọ ibinu awọn ọta rẹ, tabi lati fun ni akoko idakẹjẹ fun awọn iṣẹ pataki rẹ yii nikan ni Ọlọrun fi mu iranṣẹ Rẹ kuro ni ojutaye. Yoo yori si awọn aṣeyọri ti wọn ṣe iyebiye ju eyi lọ. Ninu idanikangbe ati ifarasin rẹ ni ibi ipamọ ori oke yii, a mu Luther kuro ninu iranlọwọ aye ati iyin eniyan. Nipa eyi, a gba a kuro lọwọ igberaga ati igbẹkẹle ara ẹni ti aṣeyọri saba maa n mu wa. Nipa ijiya ati irẹsilẹ rẹ, a pese rẹ silẹ lati rin ni alaafia ni ori oke giga ti a ṣẹṣẹ gbe si.

Bi awọn eniyan ti n yọ ninu ominira ti otitọ fun wọn, wọn saba maa n fẹ lati gbe awọn ti Ọlọrun lo lati ja ìdè èké ati igbagbọ asan ga. Satani n wa lati dari ero ati ifẹ eniyan kuro ni ọdọ Ọlọrun, ki o si tẹ ẹ mọ ara eniyan; o n dari wọn lati bu iyin fun ohun èlò lasan, ki wọn si kọ Ẹni ti o dari ohun gbogbo silẹ. Ni ọpọ igba awọn adari ẹsin ti a n yin, ti a si n bọwọ fun bayii maa n gbagbe igbẹkẹle wọn ninu Ọlọrun, wọn a si maa gbẹkẹle ara wọn. Nipasẹ eyi wọn a maa wa lati dari ọkan ati iyè awọn eniyan ti wọn fẹ lati maa wo wọn fun itọsọna dipo ki wọn maa wo ọrọ Ọlọrun. Iṣẹ atunṣe saba maa n fa sẹyin nitori pe awọn atẹle rẹ saba maa n ni iru ẹmi yii. Ọlọrun fẹ daabo bo iṣẹ Atunṣe kuro ninu ewu yii. Ko fẹ ki iṣẹ naa o gba ami eniyan bikoṣe ti Ọlọrun. Awọn eniyan ti yi oju si ọdọ Luther bi ẹni ti n waasu otitọ; a mu kuro ki oju wọn baa le yi si ọdọ Olupilese otitọ ayeraye.

9

Alatunṣe Ti Ilẹ Swistzerland

Ni yiyan awọn ohun elo fun atunṣe ijọ, a ri agbekalẹ Ọlọrun kan naa gẹgẹ bi a ti ri i ni gbigbe ijọ kalẹ. Olukọ ọrun ré awọn ẹni giga aye kọja, awọn oloruko ati ọlọrọ, ti o ti mọ lara lati maa gba iyin ati ijọsin gẹgẹ bi adari awọn eniyan. Igberaga ati idara-ẹni-loju wọn pọ ninu ifọnnu wọn gẹgẹ bi ọga ti o fi jẹ wipe a ko le kọ wọn lati ṣe ikaanu fun awọn eniyan ẹlẹgbẹ wọn ki wọn si di olubaṣiṣẹpọ pẹlu onirẹlẹ Ara Nasarẹti. Awọn ti ko mọwe, apẹja Galili ni a pé wipe: "Ẹ tẹle mi Emi yoo si sọ yin di apẹja eniyan." Matiu 4:19. Awọn ọmọ ẹyin wọnyi jẹ onirẹlẹ, wọn si ṣe e kọ. Bi ikọni èké akoko wọn ṣe ni ipa kekere lori wọn to, bẹẹ ni Kristi ṣe le dari wọn, ki O si kọ wọn fun iṣẹ Rẹ to. Bẹẹ gẹgẹ ni o ri ni akoko iṣẹ Atunṣe Nla. Awọn Alatunṣe ti wọn ṣe pataki julọ jẹ awọn ti ko lokiki—awọn eniyan ti wọn ko ni igberaga ti ipo igba naa n mu wa, ti itara alaimoye, ati ète awọn alufa ko ni ipa lori wọn. Eto Ọlọrun ni lati lo awọn ohun elo ti wọn rẹlẹ lati ṣe awọn ohun nla. A ko ni fun eniyan ni ogo naa, bikoṣe Ẹni ti o ṣiṣẹ nipasẹ wọn lati rò ati lati ṣe ifẹ inu rẹ.

Lẹyin ọsẹ diẹ ti a bi Luther ninu ile awakusa ni Saxony, a bi Ulric Zwingli si ile oluṣọ-aguntan laarin Alps. Awọn ohun ti wọn yi Zwingli ka ni igba ọmọde rẹ, ati ikọni rẹ bi o ṣe n dagba jẹ eyi ti wọn pese rẹ silẹ fun iṣẹ rẹ ni ọjọ iwaju. O dagba laarin ẹwa, ọwọ, ati titobi ohun ti a da, ọkan rẹ tete tẹ mọ titobi, ọla ati agbara Ọlọrun. Itan awọn iṣẹlẹ akikanju ti wọn ṣẹlẹ lori awọn oke abinibi rẹ yii ta ìlépa igba ọdọ rẹ ji. Ni ẹgbẹ iya agba ti o ni ifọkansin, o gbọ awọn itan ti wọn ṣe iyebiye lati inu Bibeli eyi ti o le ranti lati inu itan iṣẹnbaye ati awọn akọsilẹ ijọ. Pẹlu ifẹ ọkan ti o gbona, ọ gbọ nipa awọn iṣẹ nla awọn baba nla

ati awọn woli, ti awọn oluṣọ-aguntan ti wọn n sọ agbo ẹran wọn ni ori oke Palestine nibi ti awọn angẹli ti ba wọn sọrọ nipa Ọmọ jojolo Betlehem ati Ọkunrin Kalfari.

Bii ti Luther, baba Zwingli fẹ ki ọmọ oun o kawe, a si tete ran ọmọ naa jade kuro ninu afonifoji ile rẹ. Iye rẹ tete ji pepe, o wa di wipe nibo ni a yoo ti ri olukọ ti o kun oju oṣuwọn lati kọ. Nigba ti o pe ọmọ ọdun mẹtala, o lọ si Bern, ilu ti o ni ile ẹkọ ti o dara julọ ni Switzerland nigba naa. Ṣugbọn nibi, isoro kan dide ti o fẹ pa ina ireti ọjọ ọla rẹ. Awọn alufa onibara pinu lati fa a wa si ile awọn ajẹjẹ ẹsin. Awọn ajẹjẹ ẹsin ti Dominican ati ti Franciscan ni wọn n jijọ n jijadu fun ẹni ti o lokiki julọ. Wọn n wọna lati ri eyi nipa bi wọn ti ṣe ile ijọsin wọn lọṣọ si, bi isin wọn ti jẹ alarinrin to, ati nini awọn ohun iranti ti wọn lokiki ati awọn ère ti n ṣiṣẹ iyanu.

Awọn ẹgbẹ Dominican ti Bern ri wipe bi wọn ba le fa ọdọmọde, ọlọpọlọ akẹkọ yii mọra, wọn a ni èrè ati ọla. Bi o ti ṣe kere to, ati ẹbun abinibi rẹ gẹgẹ bi sọrọsọrọ, ati onkọwe, oye rẹ fun orin ati ewì, yoo ṣiṣẹ pupọ fun wọn ju gbogbo aṣehan ati ayẹyẹ wọn lọ lati kó awọn eniyan wa sinu isin wọn, ati lati jẹ ki owo ẹgbẹ wọn o pọ si. Wọn fẹ fi ẹtan ati ipọnni tan Zwingli wa si inu ile ẹsin wọn. Nigba ti Luther wa ni ile ẹkọ, o de ara rẹ mọ inu yara ile awọn ajẹjẹ ẹsin, araye ki ba ti mọ ọ bi ko ba i ṣe agbara Ọlọrun ti o tu silẹ. A ko gba Zwingli laaye lati koju iru ewu yii. Ọlọrun jẹ ki baba rẹ o mọ nipa ète awọn alufa alágbe yii. Ko fẹ ki ọmọ oun o gbe igbesi aye ọlẹ ati alainilari awọn alufa ajẹjẹ ẹsin. O ri wipe iwulo rẹ fun ọjọ iwaju wa ninu ewu, o si paṣẹ fun ki o wa sile kankan.

O gbọ aṣẹ baba rẹ, ṣugbọn ko tẹ ọdọ naa lọrun lati wa ninu afonifoji ile rẹ yii, laipẹ, o pada si ẹnu ẹkọ rẹ, nigba ti o lọ si Basel. Nibi ni Zwingli ti kọkọ gbọ nipa iyinrere oore ọfẹ Ọlọrun. Nigba ti Wittembach, olukọ ninu awọn ede atijọ, n kọ nipa Giriki ati Heberu, o ri Iwe Mimọ, bayi ni imọlẹ ọrun ṣe tan si ọkan awọn akẹkọ ti wọn wa ni abẹ ikọni rẹ. O sọ wipe otitọ atijọ kan wa, ti o fi ohun gbogbo niyelori ju ohun ti awọn elero ijinlẹ ati olukọ ile ẹkọ fi n kọni lọ. Otitọ atijọ yii ni wipe iku Kristi nikan ni irapada ẹlẹṣẹ. Awọn ọrọ wọnyi dabi imọlẹ ti n ba ọjọ yọ fun Zwingli.

Laipẹ a pe Zwingli lati Basel lati wa bẹrẹ iṣẹ ọjọ aye rẹ. Ile ijọsin ti o wa ni Alps ni ibi iṣẹ rẹ akọkọ, ko si jinna si afonifoji abinibi rẹ. Lẹyin ti a gbe ọwọ le lori gẹgẹ bi alufa, o "jọwọ gbogbo ọkan rẹ silẹ lati wa otitọ Ọlọrun; nitori ti o mọ daju," bi Alatunṣe akẹgbẹ rẹ ti sọ nipa rẹ, "iye ohun ti o yẹ ki oun mọ, gẹgẹ bi ẹni ti a fi agbo Kristi le lọwọ." Bi o ti n wa Iwe Mimọ si, bẹẹ ni iyatọ ti o wa laarin awọn otitọ inu rẹ ati awọn èké Romu n tubọ n fi ara han si. O jọwọ ara rẹ fun Bibeli gẹgẹ

bi ọrọ Ọlọrun, aṣẹ kan ṣoṣo ti o tọ ti ko si le baku. O ri wipe, o nilati jẹ olutumọ ara rẹ. Ko jẹ fi Iwe Mimọ gbe awọn ikọni ati igbagbọ ti o ti gba tẹlẹ lẹsẹ, ṣugbọn o ri wipe ojuṣe oun ni lati mọ ẹkọ inu rẹ ti o han kedere ni pato. O lo gbogbo ọna ti o ri lati le ni oye kikun ti o si tọna nipa itumọ rẹ, o si bẹbẹ fun iranlọwọ Ẹmi Mimọ, eyi ti o sọ wipe yoo fihan fun gbogbo awọn ti wọn ba fi tọkantọkan ati adura wa.

Zwingli sọ wipe, “Iwe Mimọ wá lati ọdọ Ọlọrun, ki i ṣe ọdọ eniyan, ani Ọlọrun ti n funni ni òye yoo fun ọ ni òye lati mọ wipe ọrọ naa ti ọdọ Ọlọrun wa. Ọrọ Ọlọrun . . . ko le baku; o mọlẹ, o n kọni funra rẹ, o n fi ara rẹ han, o n fi gbogbo igbala ati oore ọfẹ tan imọlẹ si inu ọkan, o n tu u ninu ninu Olorun, o n rẹ ẹ silẹ, ki o baa le padanu ara rẹ, ani ki o sọ ara rẹ nu, ki o si di mọ Ọlọrun.” Zwingli funra rẹ mọ itumọ otitọ awọn ọrọ wọnyi. Nigba ti o n sọ nipa iriri rẹ ni akoko yii, o kọwe wipe: “Nigba ti . . . mo bẹrẹ si nii jọwọ ara mi patapata fun Iwe Mimọ, ero ijinlẹ, ati ẹkọ nipa Ọlọrun ti a kọ ni ile ẹkọ maa n mu ero ti o yatọ wa sinu ọkan mi. Lẹyin-ọrẹyin, mo ronu wipe, ‘O nilati fi gbogbo iwọnyi silẹ, ki o si kọ nipa Ọlọrun lati inu ọrọ otitọ Rẹ nikanṣoṣo.’ Mo wa n beere lọwọ Ọlọrun fun imọlẹ Rẹ, Iwe Mimọ wa bẹrẹ si nii rọrun fun mi.”

Zwingli ko gba ikọni ti o n waasu rẹ lati ọdọ Luther. Ikọni Kristi ni. Alatunṣe ara Swiss naa sọ wipe, “Bi Luther ba n waasu Kristi, o n ṣe ohun ti mo n ṣe. Awọn ti o kó wa si ọdọ Kristi pọ ju titemi lọ. Ṣugbọn eyi ko ni itumọ. Emi ko ni jẹ orukọ miran ayafi ti Kristi, ọmọ ogun Eni ti emi i ṣe, ti o si jẹ wipe Oun nikanṣoṣo ni Balogun mi. Luther koi tii kọ iwe kankan si mi, bẹẹ ni emi koi tii kọ iwe kankan si Luther. Kilo de? . . . Ki a baa le fihan bi Ẹmi Ọlọrun ti wa ni ibamu pẹlu ara Rẹ to ni, niwọn igba ti o jẹ wipe, awa mejeeji, laipade rí n waasu ikọni Kristi ni ọna ti o ba ara wọn mu bayii.”

Ni ọdun 1516, a pe Zwingli lati wa jẹ oniwaasu ni ile awọn ajẹjẹ ẹsin ni Einsiedeln. Yoo ni oye nipa awọn iwa ibajẹ Romu si nihin, yoo si ni ipa ti yoo rin jinna kọja Alps, ilẹ abinibi rẹ gẹgẹ bi Alatunṣe. Lara awọn ohun ti wọn ṣe pataki julọ ni Einsiedeln ni ère Wundia ti a sọ wipe o ni agbara lati ṣe iṣẹ iyanu. A kọ si ara ateṛigba oju ọna ti o wọ inu ile ijọsin naa wipe, “Ẹ le ri idariji ẹṣẹ gba nibi.” Ni gbogbo igba ni awọn arinrinajo ẹsin maa n lọ si ojubọ Wundia yii; ṣugbọn ni igba ajọdun nla iyasimimọ rẹ, ọpọlọpọ eniyan maa n wa lati gbogbo ilẹ Switzerland, ani lati France ati Germany. Inu bi Zwingli pupọpupọ nitori iṣẹlẹ yii, o wa lo anfani yii lati kede ominira nipasẹ iyinrere si awọn ti igbagbọ asan ti di ni igbekun yii.

O sọ wipe, “Ẹ maṣe ro wipe Ọlọrun wa ninu tẹmpili yii ju bi O ti wa ninu gbogbo ohun ti O da lọ. Ni ibikibi ti ẹ ba n gbe, Ọlọrun

wa ni ọdọ yin, O si n gbọ yin. . . . Njẹ awọn iṣẹ ti ko ni èrè, awọn irin ajo ẹsin gigun gbọ̀ọ̀rọ̀, ọrẹ, ère, gbigbadura si Wundia tabi awọn eniyan mimọ le fun yin ni oore ọfẹ Ọlọrun bi? . . . Èrè wo ni o wa ninu ọpọlọpọ ọrọ ti a n sọ ninu adura? Anfani wo ni o wa ninu aṣọ alufa didan ti a da bo ọrùn, ori ti a fá dán, aṣọ gọrọjọ ti n fẹ lẹlẹ, tabi bata pẹkẹlẹ ti a fi wura ṣe lọṣọ? . . . Ọlọrun n wo ọkan, ọkan wa si jinna si." O sọ wipe, "Kristi, Ẹni ti a pa lẹẹkanṣoṣo ni ori agbelebu, ni ẹbọ ati ohun ti a pa fun ẹṣẹ, ti o san gbese ẹṣẹ awọn onigbagbọ titi lae."

Ọpọlọpọ awọn olugbọ rẹ ni ko faramọ awọn ikọni yii. O jẹ ijakulẹ kikoro lati sọ fun wọn wipe asan ni irin ajo oniwahala ti wọn rin. Idariji ti a fifun wọn lọfẹ nipasẹ Kristi ko ye wọn. Ọna atijọ lati de ọrun, ti Romu la kalẹ fun wọn tẹ wọn lọrun. Wọn yago kuro ninu wahala ti o wa ninu wiwá ohun ti o dara ju eyi lọ. O rọrun lati fi igbala wọn si ọwọ awọn alufa ati popu ju lati wa ọkàn mimọ lọ.

Ṣugbọn awọn ẹgbẹ miran gba iroyin igbala nipasẹ Kristi pẹlu ayọ. Awọn ohun tí Romu ni kí wọn ṣe ko mu alaafia wá sinu ọkan wọn, wọn si fi igbagbọ gba ẹjẹ Olugbala gẹgẹ bi imukuro fun ẹṣẹ wọn. Awọn wọnyi pada lọ si ile lati fi imọlẹ iyebiye ti wọn gbà han awọn miran. Bayi ni a ṣe gbé imọlẹ lati ile de ile, ilu de ilu, ti iye awọn ti wọn n wa si ojubọ Wundia si dinku jọjọ. Iye owo ọrẹ ti n wọle dinku, nitori naa, owo oṣu Zwingli, ti a n san lati inu wọn. Ṣugbọn eyi mu inu rẹ dun ni nigba ti o ri wipe agbara itara aimọkan ati ẹsin èké ti fọ.

Oju awọn alaṣẹ ijọ kò fọ si ayọrisi iṣẹ Zwingli; ṣugbọn ni akoko yii wọn ko ṣe ohun kankan si. Wọn si n reti lati yii pada si ọna wọn, wọn ṣa ipa lati mu pẹlu ọrọ ẹtan; ṣugbọn ni akoko yii, otitọ n fi ẹṣẹ mulẹ ninu ọkan awọn eniyan.

Iṣẹ Zwingli ni Einsiedeln pèsè rẹ silẹ fun iṣẹ ti o pọ si ni, eyi ti yoo bẹrẹ laipẹ. Lẹyin ọdun mẹta, a pè é wa lati jẹ oniwaasu ni katedra ti o wà ni Zurich. Eyi jẹ ilu ti o ṣe pataki julọ ninu awọn ilu ti wọn parapọ di orilẹ ede Swiss ni akoko yii, ohun ti a ba ṣe nibi yoo tan kaakiri. Awọn ijoye ijọ ti wọn pè é wa si Zurich ko fẹ ki atunṣe kankan o wà, nitori naa, wọn tẹsiwaju lati sọ awọn ojuṣe rẹ fun.

Wọn sọ fun wipe, "Wà á ṣe ohun gbogbo ti o yẹ lati gba awọn owó ti wọn tọ si ile ijọsin laifi oju fo eyi ti o kere julọ da. Wà á gba awọn onigbagbọ niyanju, lati ori pẹpẹ iwaasu, ati ninu ile ijẹwọ ẹṣẹ, lati san gbogbo idamẹwa, ati awọn owo ti o yẹ, ki wọn si fi ifẹ wọn fun ijọ han nipasẹ owo ọrẹ wọn. Wa a ṣiṣẹ daradara lati jẹ ki owo ti o n wọle lati ọdọ awọn alaisan, mass, ati lati inu gbogbo awọn ilana ijọ o pọ si." Awọn olukọ rẹ sọ fun wipe, "Fifunni ni àmì majẹmu ijọ, iwaasu, ati biboju tó agbo naa wà lara iṣẹ oniwaasu. Ṣugbọn o le gba elomiran lati ṣe eyi, ni pataki julọ fun iṣẹ iwaasu. O kò gbọdọ fun ẹnikẹni ni ami

majẹmu ayafi eniyan pataki, bi wọn ba beere fun si ni; a kì ọ nilọ lati maṣe fun ẹnikẹni laiwo ipo rẹ.”

Zwingli tẹti silẹ laisọrọ si ikilọ yii, nigba ti o n fesi, o fi imoore rẹ han fun ọla ti wọn bu fun ni pipe é wa si ipo pataki yii, o tẹsiwaju lati ṣe alaye ohun ti o gbero lati ṣe. O sọ wipe, “A ti pa igbesi aye Kristi mọ kuro ni oju awọn eniyan fun igba pipẹ. Maa waasu lori gbogbo Iyinrere ti Matiu, . . . lati orisun Iwe Mimọ nikan, maa ṣe alaye rẹ ni kikun, ni fifi awọn ẹṣẹ wé ara wọn, ati wiwa òye pẹlu adura tọkantọkan atigbadégba. Maa ṣe iṣẹ iranṣẹ mi fun ogo Ọlọrun, fun iyin Ọmọ Rẹ kanṣoṣo, fun igbala tootọ fun awọn eniyan, ati fun gbigbe igbagbọ tootọ larugẹ.” Bi o tilẹ jẹ wipe diẹ lara awọn ijoye ko fi ọwọ si ilana rẹ, ti wọn si ṣa ipá lati yi pada, Zwingli duro ṣinṣin. O sọ wipe oun kò mu ilana tuntun wá, bikoṣe ilana atijọ tí ijọ nlo ni igba iṣaaju nigba ti o wà ni mimọ.

Awọn eniyan ti n nifẹ si awọn otitọ ti o n kọni; ọpọ awọn eniyan si n wọ lọ lati gbọ iwasu rẹ. Awọn ti o ti pẹ ti wọn ti wa si ile ijọsin mọ wa ninu awọn olugbọ rẹ. O bẹrẹ iṣẹ iranṣẹ rẹ nipa ṣiṣi awọn Iyinrere, yoo ka a, yoo si ṣe alaye lori akọsilẹ ti a mi si nipa igbesi aye, ikọni ati iku Kristi si awọn olugbọ rẹ. Nibi, gẹgẹ bi o ti ṣe ni Einsiedeln, o fi ọrọ Ọlọrun han gẹgẹ bi aṣẹ kan ṣoṣo ti kò le baku, ati iku Kristi gẹgẹ bi irubọ ti o péye. O sọ wipe, “Mo fẹ lati dari yin si ọdọ Kristi—si ọdọ Kristi, ipilẹ tootọ fun igbala.” Orișiriși awọn eniyan ni wọn yí oniwaasu naa ká, lati ori awọn oloṣelu ati ọmọwe titi de ọdọ awọn onișẹ ọwọ ati agbẹ. Awọn eniyan n tẹti si ọrọ rẹ pẹlu ifẹ ọkan tootọ. Ki i ṣe wipe o n waasu igbala ti a fun ni lọfẹ nikan, ṣugbọn o fi igboya ba awọn iwa buburu ati iwa ibajẹ akoko naa wi. Ọpọlọpọ ni wọn n yin Ọlọrun logo bi wọn ti n kuro ni ile ijọsin. Wọn sọ wipe, “Oniwaasu otitọ ni ọkunrin yii. Oun ni yoo jẹ Mose wa ti yoo dari wa jade kuro ninu okunkun Ijibiti.”

Bi o tilẹ jẹ wipe a kọkọ fi idunnu gba iṣẹ rẹ, lẹyin igba diẹ, àtakò dìde. Awọn alufa ajẹjẹ ẹsin ṣiṣẹ lati dí iṣẹ rẹ lọwọ ati lati tako awọn ikọni rẹ. Awọn kan fi ṣe ẹlẹya, wọn si kẹgan rẹ; awọn miran ṣe afojudi si ti wọn si n halẹ mọ. Ṣugbọn Zwingli fi suuru fi ara da gbogbo rẹ, o sọ wipe: “Bi a ba fẹ lati jere awọn eniyan buburu si ọdọ Kristi, a nilati di oju wa si ọpọlọpọ nnkan.”

Ni aarin akoko yii, osiṣe tuntun kan wá lati ran iṣẹ atunṣe lọwọ. Ọrẹ igbagbọ ti a fọmọ yii ni Basel ran ẹnikan ti o n jẹ Lucian wa si Zurich pẹlu diẹ lara awọn iwe Luther, o sọ wipe, tita awọn iwe yii le jẹ ọna ti o lagbara lati tan imọlẹ naa ka. O kọwe si Zwingli wipe, “Woo boya ọkunrin yii ni ọgbọn ati oye ti o yẹ; bi o ba ri bẹẹ, jẹ ki o gbe awọn iṣẹ Luther kaakiri ọdọ awọn ara Swiss, lati ilu de ilu, lati ileto

de ileto, lati abule de abule, ani lati ile de ile, paapaa julọ itumọ rẹ lori Adura Oluwa, eyi ti o kọ fun awọn ọmọ ijọ. Bi a ba ti ṣe mọ wọn si bẹẹ ni awọn olubara rẹ yoo ti pọ to." Bayii ni imọlẹ ṣe ri aaye wọle.

Ni igba ti Ọlọrun n mura lati já ide aimọkan ati ẹsin èké, ni akoko naa ni Satani n ṣiṣẹ pẹlu gbogbo agbara lati ju awọn eniyan sinu okunkun ati lati dè wọn mọlẹ si. Bi awọn eniyan ti n dide ni orisirisi ilu lati fi idariji ati idalare nipasẹ ẹjẹ Kristi han awọn eniyan, Romu n tẹsiwaju pẹlu agbara lakọtun lati ṣi ọja rẹ si gbogbo ilẹ ti n ṣe ẹsin Kristẹni, o n ta idariji ẹṣẹ nitori owo.

Gbogbo ẹṣẹ ni o iye owo rẹ, ti a si n fun awọn eniyan ni aṣẹ lati dẹṣẹ laisi idiwọ, bi ile iṣura ba saa ti kun. Ẹgbẹ mejeeji yii n tẹsiwaju,—ọkan n fun ni ni idariji ẹṣẹ nitori owo, ekeji n waasu idariji ẹṣẹ nipasẹ Kristi,—Romu n faaye gba ẹṣẹ, o n sọ ọ di ọna lati ri owo; awọn Alatunṣe n ṣe ibawi ẹṣẹ, wọn n tọka si Kristi gẹgẹ bi olumukuro ẹṣẹ, ati oludande.

Awọn alufa onibara ti ẹgbẹ Dominican ni a gbe iṣẹ tita idariji ẹṣẹ fun ni Germany, Tetzel, oniwaibajẹ si ni o n ṣe adari rẹ. Ọwọ awọn ẹgbẹ Franciscan ni a fi si ni Switzerland, labẹ akoso Samson, ajẹjẹ ẹsin ara Italy. Samson ti ṣe iṣẹ ti o dara fun ijọ ná, niwọn igba ti o ti gba owo nla si inu apo ijọ padi lati Germany ati Switzerland. Nisinsinyii, o n rin ilẹ Switzerland kaakiri, ti ọpọ ero si n tẹle lẹyin, o n gba owo perete ti awọn agbẹ aroko ni lọwọ, o si n gba ẹbun nlanla lati ọdọ awọn ọlọrọ. Ṣugbọn agbara iṣẹ atunṣe naa n fi ara rẹ han ni dídí okoowo yii lọwọ, bi o tilẹ jẹ wipe kò le daa duro. Zwingli sì wà ni Einsiedeln nigba ti Samson, lẹyin ti o de si Switzerland, gbe ọja rẹ wọ inu ilu kan ti ko jina lọ. Niwọn igba ti a ti tá lólobó lori ohun ti o wa ṣe, Alatunṣe naa jade lọ ṣe atako rẹ. Awọn mejeeji kò pade ara wọn, ṣugbọn aṣeyọri Zwingli ni títú aṣiri ẹtan alufa onibara yii pọ debi wipe, o nilati fi ilu naa silẹ lọ si awọn ibomiran.

Ni Zurich, Zwingli fi itara waasu lati tako awọn ti n ta idariji ẹṣẹ; nigba ti Samson de ibẹ, iranṣẹ igbimọ ilu naa tọọ wá, o sọ fun wipe ko si aaye fun lati wọle. Pẹlu ọgbọn ẹwẹ, o ri aaye wọle nikẹyin, ṣugbọn a le kuro nibẹ laita ohun kan, laipẹ o fi Switzerland silẹ.

Ajakalẹ arun, tabi Iku Alagbara ti o wá si Switzerland ni ọdun 1519 tun fun iṣẹ atunṣe ni agbara si. Bi awọn eniyan ti n fi oju rinjú pẹlu apanirun yii, ọpọlọpọ ni wọn ri bi iwe idariji ẹṣẹ ti wọn sẹsẹ ra ti jasi asán ti ko si nitumọ to; wọn fẹ lati ni ipilẹ ti o daju fun igbagbọ wọn. Zwingli funra rẹ ri ikọlu aisan yii ni Zurich; o wọọ lara debi pe a léro wipe ara rẹ ko ni ya, a si n sọ kaakiri wipe o ti ku. Ireti ati igboya rẹ ko mi ni akoko idanwo yii. O fi igbagbọ wo agbelebu Kalfari, pẹlu igbẹkẹle ninu imukuro ẹṣẹ ti o daju. Nigba ti o pada de lati ẹnu bèbè

iku, o fi itara waasu iyinrere ju ti tẹlẹ lọ; awọn ọrọ rẹ ni agbara ti o yanilẹnu. Awọn eniyan fi ayọ ki alufa wọn ọwọn kaabọ, ẹni ti o sẹsẹ ti bèbè isa òku dé. Awọn funra wọn sẹsẹ ṣiwọ titọju alaisan ati ẹni ti n ku lọ tan ni, wọn wa mọyi iyinrere ju ti tẹlẹ lọ.

Zwingli ni oye ti o mọ gaara nipa otitọ rẹ si, o si ni iriri agbara isọdimimọ rẹ si. Iṣubu eniyan ati eto igbala ni awọn ohun ti o n waasu le lori. O sọ wipe, "Gbogbo wa di oku ninu Adamu, a tẹri sinu iwa ibajẹ ati idalẹbi." "Kristi . . . ti ra irapada ti ko le tan fun wa. . . . Ijiya rẹ jẹ . . . irubọ ayeraye, ti o si lè woni sàn patapata titi lae; ó tu idajọ Ọlọrun loju titi lae fun gbogbo ẹni ti o ba gbẹkẹle pẹlu igbagbọ ti o duro ṣinṣin, ti ko yẹ." Sibẹ, o fi kọni kedere wipe eniyan ko ni ominira lati tẹsiwaju ninu ẹṣẹ nitori oore ọfẹ Kristi. "Nibikibi ti a ba ti ni igbagbọ ninu Ọlọrun, nibẹ ni Ọlọrun wa; nibikibi ti Ọlọrun ba wa, itara ti n muni ṣe iṣẹ rere yoo wa nibẹ pẹlu."

Ifẹ awọn eniyan si iwaasu Zwingli pọ to bẹẹ gẹẹ ti ile ijọsin a kun akunfaya pẹlu awọn ero ti won wa n gbọ ọ. Diẹdiẹ, ní bi wọn ti ṣe le gba a, o n ṣipaya otitọ si awọn olugbọ rẹ. O sọra lati maṣe kọkọ waasu awọn ohun ti yoo dáyàfò wọn, ti yoo si fa ikunsinu. Iṣẹ rẹ ni lati jere ọkan wọn sinu ẹkọ Kristi, lati ṣẹ wọn rọ pẹlu ifẹ Rẹ, ati lati gbe apẹẹrẹ rẹ siwaju wọn; bi wọn ba ṣe n gba ikọni iyinrere, bẹẹ ni igbagbọ ati iṣẹ asan wọn yoo maa ṣi kuro.

Diẹdiẹ ni iṣẹ Atunṣe naa n tẹsiwaju ni Zurich. Awọn ọta rẹ bẹrẹ atako kikan pẹlu ibẹru. Ni ọdun kan sẹyin, ajẹjẹ ẹsin ti Wittenberg ti ṣe rárá si popu ati ọba ni Worms, ó wa dabi ẹnipe ohun gbogbo n tọka si iru ikọsilẹ aṣẹ popu kan naa ni Zurich. A ṣe atako lemọlemọ si Zwingli. Ni gbogbo igba ni a n dana sun awọn atẹle iyinrere ni agbegbe awọn atẹle popu, ṣugbọn eyi kò tó; a nilati pa olukọ ẹkọ odi lẹnu mọ. Lati ṣe eyi, bishọbu Constance ran aṣoju mẹta lọ si igbimọ ni Zurich, wọn fi ẹsun kan Zwingli wipe o n kọ awọn eniyan lati tako awọn ofin ijọ, o si n tipa eyi da alaafia ati eto daradara ti o wa ninu awujọ ru. O sọ wipe bi a ba kọ aṣẹ ijọ silẹ, idarudapọ yoo bẹ silẹ nibi gbogbo. Zwingli dahun wipe òun ti n kọni ni iyinrere ni Zurich, "eyi ti o ni alaafia ati idakeje ju ilukilu lọ ninu orilẹ ede naa" fun ọdun mẹrin. O wa sọ wipe, "Njẹ ẹsin Kristẹni kọ ni o wa dara julọ fun aabo gbogbo eniyan bi?"

Awọn aṣoju naa gba awọn alaṣẹ adugbo niyanju lati duro ninu ijọ, ati pe laisi rẹ, ko si igbala. Zwingli dahun wipe: "Ẹ maṣe jẹ ki ifẹsunkanni yii o da yin laamu. Ipilẹ ijọ ni Apata kan naa, Kristi kan naa, ti o fun Peteru ni orukọ rẹ, nitori ti o fi ododo jẹwọ Rẹ. Ọlọrun gba ẹnikẹni lati gbogbo orilẹ ede ti o ba gbagbọ ninu Jesu Oluwa pẹlu gbogbo ọkan rẹ. Eyi ni ijọ tootọ, ti ẹnikẹni ti ko ba si ninu rẹ kò

le ri igbala.” Nitori apero yii, ọkan ninu awọn aṣoju bisọbu naa gba igbagbọ ti a fọ mọ.

Igbimọ naa kọ lati gbe igbesẹ kankan lati tako Zwingli, Romu wa mura fun atako miran. Nigba ti Alatunṣe naa gbọ nipa ète awọn ọta rẹ, o sọ wipe: “Jẹ ki wọn maa bọ; mo bẹru wọn bi bebe okuta ti n bẹru omi ti n ru nisalẹ rẹ.” Akitiyan awọn oloye ijọ tubọ n jẹ ki iṣẹ ti wọn fẹ bì ṣubu o maa tẹsiwaju si ni. Otitọ naa n tẹsiwaju lati tan kalẹ. Bi Luther ti poora ba ọkan awọn atẹle rẹ jẹ ni Germany, ṣugbọn wọn tun mọkan le bi wọn ti ri bi iyinrere ti n tẹsiwaju ni Switzerland.

Bi iṣẹ Atunṣe ti n fesẹ mulẹ ni Zurich, ayọrisi rẹ fi ara han daradara ni titẹ iwa ọdaran rì, ti o si n jẹ ki èto ati alaafia o jọba. Zwingli kọwe wipe, “Alaafia ṣe ibugbe rẹ sinu ilu wa, kò si ija, kò si agabagebe, ko si ìjowú, ko si wahala. Nibo ni iru iṣọkan bayi tile wá bikoṣe lati ọdọ Oluwa, ati awọn ikọni wa ti wọn fi èso alaafia ati iwabi-ọlọrun kun inu wa?”

Awọn iṣẹgun ti iṣẹ Atunṣe n ri tubọ n ru awọn ẹlẹsin Romu ninu soke si ni, wọn si sa ipa si lati bi i ṣubu. Nigba ti wọn ri aṣeyọri kekere ti wọn ṣe nipa ṣiṣe inunibini lati tẹ iṣẹ Luther ri ni Germany, wọn pinu lati fi ohun ija iṣẹ atunṣe koju rẹ. Wọn yoo ṣe ariyanjiyan pẹlu Zwingli, wọn yoo ṣe eto ohun gbogbo silẹ lati ri wipe wọn ṣẹgun nipa yiyan ibi ijiroro funra wọn, ki i ṣe eyi nikan, ṣugbọn wọn a tun yan awọn ti yoo ṣe idajọ ariyanjiyan naa. Bi wọn ba si tile ni Zwingli ni ikawọ wọn, wọn a ri wipe ko bọ mọ wọn lọwọ. Bi wọn ba ti pa olori rẹ lẹnu mọ, ẹgbẹ naa yoo fọ ni kiakia. Ṣugbọn wọn fi ète yii ṣe asiri.

A yan Baden gẹgẹ bi ibi ti a o ti ṣe ariyanjiyan yii; ṣugbọn Zwingli ko si nibẹ. Awọn igbimọ Zurich ni ifura si ète awọn ẹlẹsin popu, bi wọn ti n danasun awọn ti wọn ṣe ijẹwọ iyinrere ni agbegbe awọn atẹle popu sì ti kì wọn nilọ, nitori naa, wọn ko jẹ ki alufa wọn o fi ara rẹ si inu ewu. Ni Zurich, o ṣetan lati koju gbogbo awọn aṣoju ti Romu ba le ran; ṣugbọn lati lọ si Baden, nibi ti a ti ta ẹjẹ ọpọlọpọ awọn ajẹriku fun otitọ silẹ, yoo tumọ si wiwọ ẹnu iku lọ. A yan Oecolampadius ati Haller lati ṣe aṣoju Alatunṣe naa, nigba ti ilumọọka Dr Eck, ti ọpọlọpọ awọn ọmọwe ati alufa agba ti lẹyin jẹ olugbeja Romu.

Bi o tilẹ jẹ wipe Zwingli ko si ninu apero naa, a ri ipa rẹ. Awọn atẹle popu nikan ni wọn yan awọn akọwe, wọn si kilọ fun ẹnikẹni lati maṣe kọ ohunkohun silẹ bi wọn ko ba fẹ ku. Pẹlu eleyi, Zwingli n gba iroyin kikun lori ohun ti wọn sọ ni Baden. Akẹkọ kan ti o wa ni ibi ariyanjiyan yii n ṣe akọsilẹ awọn ohun ti wọn ba sọ ni ọjọ naa bi o ba ti di aṣalẹ. Awọn akẹkọ meji kan a wa ko awọn iwe wọnyi, pẹlu awọn lẹta Oecolampadius, lọ si ọdọ Zwingli ni Zurich. Alatunṣe naa a dahun si wọn, o n gba wọn niyanju, o si n fun wọn ni imọran. Aṣalẹ ni o n

kọ lẹta tirẹ, awọn akẹkọ wọnyi a si ko wọn dani pẹlu wọn lọ si Baden ni aarọ. Lati maṣe jẹ ki awọn asọbode ilu naa o funra si wọn, awọn iranṣẹ wọnyi a gbe àgò adiyẹ sori, à á sì jẹ ki wọn kọja laisi idiwọ.

Bayi ni Zwingli ṣe tẹsiwaju lati ba awọn alatako rẹ ti wọn jẹ alarekereke jagun. Myconius sọ wipe, o “ṣiṣẹ pupọ nipa ironu rẹ, àisun rẹ, ati imọran ti o n rán lọ si Baden, ju eyi ti i ba ṣe bi o ba funra rẹ wà nibè, ti o n jiroro pẹlu awọn ọta rẹ lọ.”

Inu awọn ẹlẹsin Romu ti n dun wipe awọn ni yoo ṣẹgun, nitori naa, wọn wa si Baden pẹlu aṣọ olowo iyebiye ati awọn ohun ọṣọ ara didan. Wọn n gbe igbesi aye ọlọrọ, ti tabili wọn si kun fun onjẹ olowo iyebiye ati ọti waini ti o dara julọ. Wọn n ṣe ẹfẹ, wọn si n ṣe ariya alariwo lati le dá ara wọn lara yá lẹyin wahala iṣẹ ìjọ. Awọn Alatunṣe yatọ patapata si eyi; awọn eniyan n wo wọn gẹgẹ bi ẹni ti o fi diẹ san ju awọn onibara lọ, awọn ti onjẹ perete ti wọn n jẹ ki i jẹ ki wọn pẹ lori tabili onjẹ. Ẹni ti o gba Oecolampadius sile n wo o ninu yara rẹ, o ri wipe biko ba kawe, a maa gbadura, o wa yaa lẹnu jọjọ, ti o fi sọ wipe ẹlẹkọ odi naa saa jẹ “olufọkansin pupọpupọ.”

Ninu apero naa, “Eck fi igberaga gun ori pẹpẹ iwasu ti a ṣe lọsọ pupọpupọ, nigba ti Oecolampadius, onirele, ẹni ti aṣọ rẹ ko lowo lori joko niwaju alatako rẹ lori apoti kan ṣa.” Ohùn Eck rinlẹ, idaniloju rẹ ko si ba a ku. Itara rẹ tun lagbara si nitori ireti goolu ati okiki; nitori owo nla ni a yoo fi ta olugbeja igbagbọ lọrẹ. Nigba ti sisọrọ ti o mọgbọn wa bàkù, o bẹrẹ si nii sọrọ ni ọna itabuku, ti o si n bura.

Oecolampadius wa ni iwọntuwọnsi, kò si gbẹkẹle ara rẹ, o súnrakì kuro ninu wahala naa, ṣugbọn nisinsinyii, o wọ inu rẹ pẹlu ileri ọlọwọ wipe: “Emi ko mọ odiwọn kan fun idajọ ayafi ọrọ Ọlọrun.” Bi o tilẹ jẹ wipe o jẹ onirẹlẹ, ti o si n bọwọ fun ni ninu iwa rẹ, o fi ara rẹ han gẹgẹ bi ẹni ti o kun oju oṣuwọn, ti o si duro ṣinṣin. Nigba ti awọn ẹlẹsin Romu, gẹgẹ bi iṣe wọn, n lo aṣa ijọ, Alatunṣe naa duro gbọingbọin pẹlu Iwe Mimọ. O sọ wipe, “Aṣa ko ni agbara ni Switzerland, ayafi bi o ba wa ni ibamu pẹlu iwe ofin; ninu ọrọ igbagbọ, Bibeli ni iwe ofin wa.”

Iyatọ ti o wa laarin awọn olujiyan mejeeji yii ni ipa. Iṣọwọronu Alatunṣe ti o da ṣaka, ti o gbé kalẹ pẹlu irẹlẹ ati suuru, ni itumọ loju awọn ti wọn fi irira yipada kuro ni ọdọ ifọnnu ati ariwo Eck.

Ọjọ mejidinlogun ni wọn fi ṣe apero naa. Ni opin rẹ, awọn atẹle popu fi igboya sọ wipe awọn ni wọn gbégbá orókè. Ọpọlọpọ awọn ijoye ni wọn ti Romu lẹyin, igbimọ naa kede wipe awọn Alatunṣe naa baku, a tun sọ wipe, ati awọn, ati olori wọn Zwingli, a yọ wọn kuro ninu ijọ. Ṣugbọn awọn eso àpérò naa fi awọn ti wọn ni ajulọ han. Ijakadi naa fun iṣẹ awọn Protestant lokun si ni, ko si pẹ pupọ lẹyin eyi ti awọn ilu Bern ati Basel ṣe ijẹwọ lati tẹle iṣẹ Atunṣe.

10

Ìdàgbàsokè iṣẹ Àtunṣe Ní Germany

Bi Luther ti poora ni ọna ti a ko le ṣe alaye rẹ fa ibinu kaakiri gbogbo Germany. A n beere nipa rẹ ni ibi gbogbo. A n sọ awọn àhesọ ti wọn buru julọ nipa rẹ, ti ọpọlọpọ si gbagbọ wipe a ti pa a. Ọpọ eniyan ṣọfọ nitori rẹ, ki i ṣe awọn ọrẹ rẹ nikan, ṣugbọn ati awọn ẹgbẹgbẹrun ti wọn koi ti i fi ipinu wọn han nigbangba lati ṣe atilẹyin iṣẹ Atunṣe. Ọpọ ninu wọn ni wọn si da majemu wipe wọn yoo gbẹsan iku rẹ.

Awọn adari ẹsin Romu bẹru lati ri bi ikorira awọn eniyan si wọn ti pọ to. Bi o tilẹ jẹ wipe inu wọn kọkọ dun nigba ti wọn ro wipe Luther ti ku, laipẹ, wọn fẹ lati fi ara pamọ kuro ninu ibinu awọn eniyan. Iwa ogboju rẹ ko damu awọn ọta rẹ nigba ti o wa ni aarin wọn bii ti igba ti a mu kuro ni aarin wọn. Awọn ti wọn n wọna lati pa Alatunṣe onigboya naa ninu ibinu wọn wa n bẹru nisinsinyii nigba ti o di ẹni igbekun ti ko le ran ara rẹ lọwọ. Ẹnikan sọ wipe, "Ọna kan ṣoṣo ti o ṣẹku lati gba ara wa la ni lati tan fitila, ki a wa Luther kaakiri gbogbo aye, ki a si da pada fun orilẹ ede ti n beere fun." Aṣẹ ọba ko ni agbara mọ. Inu bi awọn aṣoju popu nigba ti wọn ri wipe awọn eniyan ko fi iyè si wọn bi wọn ti ṣe fi iye si ohun ti o ṣẹlẹ si Luther.

Iroyin wipe o wa ni alaafia, bi o tilẹ jẹ wipe ẹlẹwọn ni ṣẹ ibẹru awọn eniyan rọ, ṣugbọn o tun fi ifẹ rẹ kun wọn lọkan si. Awọn eniyan n fi itara ka awọn iwe rẹ ju ti tẹlẹ lọ. Iye awọn eniyan ti wọn darapọ mọ iṣẹ akọni, ti ko bẹru ohun ti yoo ṣẹlẹ, ṣugbọn ti o duro ti ọrọ Ọlọrun yii, tubọ n pọ si. Iṣẹ Atunṣe tubọ n ni agbara si lojoojumọ. Irugbin ti Luther gbin wu ni ibi gbogbo. Aisinile ṣe iṣẹ ti i ba baku lati ṣe bi o ba wa nile. Awọn oṣiṣẹ miran ri ojuṣe tuntun, niwọn igba ti olori nla wọn ko si mọ. Pẹlu igbagbọ tuntun ati ifọkansin, wọn tẹsiwaju

pẹlu ohun gbogbo ti agbara wọn le ṣe, ki iṣe ti o bẹrẹ daradara ma baa ni idiwọ.

Ṣugbọn Satani ko kawọ gbinra. O wa ṣe ohun ti o saba maa n ṣe ni gbogbo igba ti ẹgbẹ alatunṣe ba dide—lati tan awọn eniyan jẹ, ati lati pa wọn run nipa fifun wọn ni ayederu dipo iṣẹ tootọ. Bi awọn èké Kristi ti wa ni ọrundun akọkọ ni ijọ Kristẹni, bẹẹ gẹgẹ ni awọn woli èke dide ni ọrundun kẹrindinlogun.

Awọn eniyan diẹ, ti wọn ni imọlara ohun ti o n ṣẹlẹ ninu ilana ẹsin, ni ero wipe wọn ti gba ifihan pataki lati ọrun, wọn si n sọ wipe Ọlọrun ti yan wọn lati pari iṣẹ Atunṣe ti Luther fi imẹlẹ bẹrẹ. Ni tootọ, wọn n yi iṣẹ ti o ṣe pada ni. Wọn kọ otitọ nla ti o jẹ ipilẹṣẹ iṣẹ Atunṣe silẹ—wipe ọrọ Ọlọrun jẹ odiwọn ti o tọ ti o si peye fun igbagbọ ati iṣesi; wọn si fi odiwọn èrò ọkan, ati imọlara ẹmi wọn ti ko daju ti o si n yipada rọpo. Nipa bi wọn ti yẹ ohun nla ti o n da irọ ati aṣiṣe mọ si ẹgbẹ kan yii, ọna ṣi silẹ fun Satani lati maa dari ọkan awọn eniyan bi o ti fẹ.

Ọkan ninu awọn woli yii sọ wipe angẹli Gabrieli ni o kọ oun. Akẹkọ kan ti o dara pọ mọ fi ẹkọ rẹ silẹ, o n sọ wipe, Ọlọrun funra rẹ ti fun oun ni ọgbọn lati ṣe itumọ ọrọ Rẹ. Awọn miran ti wọn ni ẹmi igbonaraju ẹsin dara pọ mọ wọn. Ki i ṣe ariwo kekere ni iṣesi awọn alara gbigbona ẹsin yii da silẹ. Iwaasu Luther mu ki awọn eniyan ni ibi gbogbo o ri idi ti a fi nilo atunṣe, ṣugbọn nisinsinyii, irọ awọn woli tuntun yii ṣi awọn olootọ eniyan diẹ lọna.

Awọn adari ẹgbẹ yii lọ si Wittenberg, wọn si sọ igbagbọ wọn fun Melancthon ati awọn alabasiṣẹpọ rẹ. Wọn sọ wipe: "Ọlọrun ni o ran wa wá lati ki awọn eniyan nilọ. A ti bá Oluwa sọrọ; a mọ ohun ti yoo ṣẹlẹ; ni ọrọ kan, a jẹ apostoli ati woli, a si wa lati ba Dr Luther sọrọ."

Ẹnu ya awọn Alatunṣe, iporuuru ọkan si mu wọn, wọn koi ti i ri iru eleyi ri, nitori naa wọn ko mọ ohun ti wọn yoo ṣe. Melancthon so wipe: "Ẹmi ti o yatọ wa ninu awọn eniyan wọnyi lootọ; ṣugbọn iru ẹmi wo ni? . . . . Ni ọna akoko, ẹ jẹ ki a sọra lati maṣe pa ina Ẹmi, ṣugbọn ni idakeji, ki a ṣọra ki ẹmi Satani maṣe ṣi wa lọna."

Eso ẹkọ tuntun yii fi ara han laipẹ. O jẹ ki awọn eniyan o kọ Bibeli silẹ, tabi ki wọn paáti patapata. Idarudapọ de ba awọn ile ẹkọ. Awọn akẹkọ kọ gbogbo ikora-ẹni-nijanu silẹ, wọn kọ ẹkọ wọn silẹ, wọn si fi ile ẹkọ giga silẹ. Awọn ti wọn ro wipe wọn kun oju oṣuwọn lati ta iṣẹ Atunṣe ji, ati lati dari rẹ tilẹ n ti i si bebe iparun ni. Awọn ẹlẹsin Romu wa ni igboya wọn pada, wọn si sọ pẹlu idunnu wipe: "Ijakadi kan ṣoṣo ni o ku, gbogbo re yoo si jẹ tiwa."

Nigba ti Luther, ti o wa ni Wartburg gbọ ohun ti o ṣẹlẹ yii, o sọ pẹlu aniyan wipe: "Mo ti n reti wipe Satani yoo ran wahala yii si wa." O woye iwa awọn ti wọn n pe ara wọn ni woli wọnyi o si ri ewu ti o fẹ

wu iṣẹ otitọ. Atako popu ati ti ọba kò fun ni wahala ati aniyan ọkan ti ó wa n ni nisinsinyii. Awọn ọta ti o buru julọ fun iṣẹ Atunṣe jade lati inu awọn ti wọn pe ara wọn ni ọrẹ rẹ. Awọn otitọ ti wọn fun ni ayọ nla ati itunu ni a wa n lo lati fa wahala, ti a si n fi n da idarudapọ silẹ ninu ijọ.

Ẹmi Ọlọrun ni o ran Luther lọwọ ninu iṣẹ Atunṣe, o si ṣe e ju bi agbara rẹ ti mọ lọ. Ko ro lati ṣe awọn ipinu ti o ṣe, tabi lati ṣe awọn ayipada nla ti o ṣe. O jẹ ohun elo ni ọwọ Agbara Ayeraye. Sibẹ o wariri fun ayọrisi iṣẹ rẹ. O sọ nigba kan wipe: "Bi mo ba ri wipe ikọni mi pa ẹnikan lara—eniyan kan ṣoṣo, bi o tile wu ki o jẹ ẹni yẹpẹrẹ, ti ko si lokiki to,—eyi ti ko le ṣe nitori iyinrere funra rẹ ni,—maa yan lati ku ni ẹẹmẹwa ju ki n kọ lati yipada lọ."

Ni akoko yii, Wittenberg funra rẹ, aarin gungun iṣẹ Atunṣe funra rẹ, n yara ṣubu sabẹ agbara igbonara ẹsin ati iwa ailofin. Awọn iṣẹlẹ buburu yii ko waye nitori awọn ikọni Luther; ṣugbọn awọn ọta rẹ n fi ẹsun yii kan an kaakiri gbogbo ilẹ Germany. Ninu ẹdun ọkan rẹ, o maa n beere nigba miran wipe: "Ṣe bi opin yoo ti deba iṣẹ Atunṣe niyii?" Ṣugbọn bi o ti ba Ọlọrun jijadu ninu adura, alaafia wa sinu ọkan rẹ. O sọ wipe, "Iṣẹ naa ki i ṣe temi, ṣugbọn ti Rẹ ni, Iwọ ko ni jẹ ki igbonara ẹsin, tabi ẹkọ eke o ba a jẹ." Ṣugbọn ko le fi ara da a ki oun o kuro loju ija ni iru akoko wahala yii. O pinu lati pada si Wittenberg.

Ni kia, o bẹre irin ajo elewu yii. A ti le kuro ninu ilu. Awọn ọta ni ominira lati pa; a ti ki awọn ọrẹ rẹ nilọ lati maṣe ran an lọwọ tabi gba a silẹ. Ijọba n ṣe atako si awọn atẹle rẹ lọna ti o buru julọ. Ṣugbọn o ri ti ewu n wu iṣẹ iyinrere, o si jade lọ ni oruko Oluwa, laibẹru, lati ja fun otitọ.

Ninu lẹta ti o kọ si afọbajẹ, nigba ti o sọ ipinu rẹ lati kuro ni Wartburg, Luther sọ wipe: "Jẹ ki o di mimọ fun ọlanla rẹ wipe mo n lọ si Wittenberg labẹ aabo ti o fi ohun gbogbo ga ju ti awọn ijoye tabi ti afọbajẹ lọ. Mi o ro lati beere fun iranlọwọ ọlọlajulọ rẹ, bẹẹ ni mi o fẹ aabo rẹ, dipo bẹẹ, maa daabo bo ọ funra mi. Bi mo ba mọ wipe ọlọlajulo rẹ le tabi yoo daabo bo mi, mi o ni lọ si Wittenberg rara. Ko si ida kan ti o le jẹ ki iṣẹ yii o tẹsiwaju. Ọlọrun nikan ni o nilati ṣe ohun gbogbo, laisi iranlọwọ tabi atilẹyin eniyan. Ẹni ti o ba ni igbagbọ ti o tobi julọ ni o le daabo boni julọ."

Ninu lẹta keji ti o kọ loju ọna Wittenberg, Luther fi kun pe: "Mo ṣetan lati gba aidunnu ọlọlajulọ, ati ibinu gbogbo aye. Ṣe ki i ṣe awọn ara Wittenberg ni aguntan mi ni? Ṣe Ọlọrun kọ ni o fi wọn fun mi ni? Ṣe ko wa yẹ bi o ba nilo bẹẹ, lati koju iku nitori wọn? Ati wipe, mo bẹru lati ri ajalu nla ti o fẹ ṣẹlẹ ni Germany, eyi ti Ọlọrun yoo fi ṣe idajọ fun orilẹ ede wa."

O bẹrẹ iṣẹ rẹ pẹlu iṣọra, irẹlẹ, sibẹ pẹlu ipinu ati iduroṣinṣin. O sọ wipe, “Ọrọ Ọlọrun ni a nilati fi bi ohun ti a fi iwa ipa tedo lulẹ, ti a si nilati fi párun. Emi ko ni wu iwa ipa lati tako awọn onigbagbo asan ati alaigbagbọ. . . . A ko nilati fi ipa mu ẹnikẹni. Ominira ni pataki igbagbọ.”

Ko pẹ ti a royin rẹ kaakiri Wittenberg wipe Luther ti pada de, ati pe oun ni yoo waasu. Awọn eniyan rọ wa lati iha gbogbo, ile ijọsin si kun akunfaya. O gun ori pẹpẹ iwaasu, o si fi ọgbọn ati irẹlẹ ṣe ikọni, igbaniniyanju, ati ibaniwi. O sọ nipa awọn ti wọn n wuwa jagidijagan lati kasẹ mass kuro nilẹ wipe:

“Mass ki i ṣe ohun ti o dara; Ọlọrun tako o; o yẹ ki a kasẹ rẹ kuro nilẹ; maa si fẹ ki a fi ounjẹ alẹ Oluwa ti iyinrere rọpo rẹ kaakiri gbogbo aye. Ṣugbọn ẹ maṣe jẹ ki a fi ipa mu ẹnikẹni kuro ninu rẹ. A nilati fi ọrọ naa si ọwọ Ọlọrun. Awa kọ ni yoo ṣe iṣẹ naa bikoṣe ọrọ Rẹ. Ẹ ẹ beere wipe kilo de ti o fi nilati ri bẹẹ? Nitori pe mi o ni ọkan awọn eniyan ni ọwọ mi bi amọkoko ti i ni amọ. A ni ẹtọ lati sọrọ: a ko ni ẹtọ lati muni ṣe e. Ẹ jẹ ki a waasu; Ọlọrun ni ó ni eyi ti o ku. Bi o ba ṣe wipe mo lo iwa ipá ni, kini i ba jẹ ere mi? Irora, aṣa, idibọn, iṣẹ eniyan ati agabagebe. . . . Ko ni si iṣotitọ atọkanwa, igbagbọ tabi ifẹ. Nibi ti awọn mẹtẹẹta wọnyi ko ba si, ko si ohun ti o wa nibẹ, mi o si ni fẹ lati ni iru ayọrisi yii. . . . Ọlọrun n ṣiṣẹ pẹlu ọrọ Rẹ ju eyi ti emi ati iwọ ati gbogbo aye bi a ba pa okun wa pọ le ṣe lọ. Ọlọrun n fi ọwọ ba ọkan; bi a ba si ti jere ọkan, a ti jere ohun gbogbo. . . .

“Maa ṣe iwasu, maa ṣe ijiroro, maa si kọwe; ṣugbọn mi o ni fi ipa mu ẹnikẹni, nitori iṣẹ atinuwa ni igbagbọ jẹ. Ẹ wo ohun ti mo ti ṣe. Mo tako popu, tita idariji ẹṣẹ, ati awọn ẹlẹsin popu, ṣugbọn ki i ṣe pẹlu ija tabi iwa ipa. Mo gbe ọrọ Ọlọrun siwaju; mo waasu, mo tun kọwe—ohun ti mo ṣe ko ju yẹn lọ. Sibẹ nigba ti mo n sun, . . . ọrọ iwaasu bi ẹsin popu ṣubu, ko si si ọba kan tabi ijoye ti o le ṣe e ni iru ijamba yii. Sibẹ, mi o ṣe ohun kankan; ọrọ naa ni o ṣe gbogbo rẹ. Bi o ba ṣe wipe mo fẹ lati lo iwa ipa ni, gbogbo ilẹ Germany ni i ba ti kun fun ẹjẹ. Ṣugbọn ki ni eyi i ba yọri si? Iparun ati idibajẹ ara ati ọkan. Nitori naa, mo dakẹ, mo si jẹ ki ọrọ naa o maa danikan rin kaakiri aye.

Luther n waasu fun ọpọ awọn ero ti wọn n fẹ lati gbọ ọ fun ọsẹ kan gbako lojoojumọ. Ọrọ Ọlọrun fọ agbara irusoke igbonara ẹsin. Agbara iyinrere si da awọn ti a ṣi lọna pada si oju ọna otitọ.

Luther ko ni ero lati tako awọn alaragbigbona ẹsin, awọn ti iṣẹ wọn ti fa iwa buburu nla. O ri wọn bi ẹni ti iwoye wọn ko jinlẹ to, ti kò kó itara wọn nijanu, awọn ti wọn n sọ wipe wọn gba imọlẹ pataki lati ọrun, ṣugbọn ti wọn ko le fi ara da atako kekere, tabi ibawi tabi imoran ti a funni ninu aanu. Wọn ri ara wọn bi ẹni ti o ni aṣẹ ti o ga

julọ, wọn fẹ ki gbogbo eniyan o gba aṣẹ wọn laisi ibeere. Ṣugbọn bi wọn ti sọ wipe wọn fẹ ba ni ijiroro, o gba lati pade wọn. O si fi iwa èké wọn han to bẹẹ gẹẹ ti awọn opuro wọnyii fi nilati fi Wittenberg silẹ lọgan.

Erokero nipa ẹsin yii dawọ duro fun igba diẹ; ṣugbọn lẹyin ọdun diẹ, o gbilẹ kan pẹlu agbara nla, o si ṣe awọn iṣẹ buburu nla pẹlu. Luther sọ nipa awọn adari ẹgbẹ yii pe: “Iwe Mimọ dabi oku lẹta, gbogbo wọn si bẹrẹ si nii kigbe, ‘Ẹmi! Ẹmi!’ Ṣugbọn dajudaju mi o ni tẹle wọn lọ si ibi ti ẹmi wọn n dari wọn lọ. Ki Ọlọrun aanu o pami mọ kuro ninu ijọ ti ko si awọn miran ayafi awọn eniyan alailẹṣẹ. Mo fẹ lati gbe pẹlu awọn onirẹlẹ, alailagbara, alaisan, ti wọn mọ, ti wọn si ni imọlara ẹṣẹ wọn, ti wọn n kerora, ti wọn si n kigbe nigbagbogbo si Ọlọrun lati isalẹ ọkan wọn lati gba itunu ati iranlọwọ Rẹ.”

Thomas Munzer, ẹni ti o ṣe akitiyan julọ ninu awọn elerokero ẹsin jẹ ẹni ti o ni ẹbun, eyi ti o ṣe wipe bi o ba lo o daradara, yoo ran an lọwọ lati ṣe rere; ṣugbọn koi tii kọ ẹkọ akọkọ nipa ẹsin tootọ. “O ni ifẹ lati ṣe atunṣe gbogbo aye, o ti gbagbe, gẹgẹ bi gbogbo awọn onitara ti maa n ṣe, wipe iṣẹ atunṣe nilati bẹrẹ pẹlu oun gan alára.” O ni ifẹ lati ni ipo ati agbara, ko si fẹ lati jẹ ẹnikeji, ani fun Luther paapa. O sọ wipe ni fifi Iwe Mimọ ropo popu, awọn Alatunṣe tilẹ n gbe iru ẹsin popu miran kalẹ ni. O sọ wipe a ti yan oun lati ọrun lati wa fi iṣẹ atunṣe tootọ han. Munzer sọ wipe, “Ẹnikẹni ti o ba ni ẹmi yii, ní igbagbọ tootọ, bi ko ba tilẹ tii ri Iwe Mimọ ri ni gbogbo ọjọ aye rẹ.”

Awọn olukọ elerokero wọnyi n fi ara wọn silẹ lati jẹ ki ero ọkan wọn o maa dari wọn, wọn ri gbogbo ero, ati imọlara gẹgẹ bi ohùn Ọlọrun; nitori naa, wọn ṣe e ni aṣeju. Awọn miran sun Bibeli wọn níná, wọn wipe: “Lẹta n pani, ṣugbọn Ẹmi n funni ni iye.” Ikọni Munzer nipa lori ifẹ eniyan lati ri ohun agbayanu, o tun n tẹ igberaga wọn lọrun nipa gbigbe ero ati igbagbọ eniyan ga ju ọrọ Ọlọrun lọ. Ọpọ eniyan ni wọn gba awọn ikọni rẹ. Laipẹ, o kọ gbogbo eto ninu isin apapọ silẹ, o tun sọ wipe gbigbọran si awọn ijoye lẹnu tumọsi sisin Ọlọrun ati Beliali.

Ọkan awọn eniyan ti o ti bẹrẹ si nii kọ ajaga popu silẹ, ti bẹrẹ si nii ṣe waduwadu labẹ ikoninijanu aṣẹ ilu. Awọn ikọni ayi-nnkan pada ti Munzer fi n kọni, ti o n fi Ọlọrun ṣe atilẹyin rẹ, mu ki wọn kuro labẹ gbogbo akoso patapata, ti wọn si fi akoso fun aimọkan, ati itara wọn. Irukerudo ati ija nla ni o tẹle, ti ilẹ Germany si kun fun ẹjẹ.

Irora ọkan ti Luther ti ni mọ fun ọjọ pipẹ ṣaaju iriri rẹ ni Erfurt wa kun ọkan rẹ ni ilọpo meji bi o ti n ri abayọri irokuro ẹsin, ti a si n di ẹbi rẹ ru iṣẹ Atunṣe. Awọn ijoye ẹlẹsin popu sọ wipe—ọpọ si ṣetan lati gba ọrọ naa gbọ—wipe iṣọtẹ naa jẹ ayọrisi awọn ikọni Luther.

Bi o tilẹ jẹ wipe ẹsun yii ko fi ẹsẹ mulẹ rara, o ko iporuuru ọkan ba Alatunṣe naa. Wipe a dojuti iṣẹ otitọ nipa gbigbe si ipo kan naa pẹlu erokero ti o buru julọ ju ohun ti o le farada lọ. Ni ọna keji, awọn adari ninu iṣọtẹ naa korira Luther nitori pe, ki i ṣe wipe o tako awọn ikọni wọn nikan, ṣugbọn o tun n sọ wipe ko ti ọdọ Ọlọrun wa, o tun pe wọn ni ọlọtẹ si aṣẹ ijọba. Ni ìfèsì, wọn pe e ni opuro buruku. O dabi ẹnipe ó kó ikorira awọn ijoye ati ti awọn eniyan si ori ara rẹ.

Inu awọn ẹlẹsin Romu dun, wọn n reti iṣubu iṣẹ Atunṣe; wọn si n bu Luther, ani fun awọn aṣiṣe ti o n fi tọkantọkan n ṣiṣẹ lati ṣe atunṣe rẹ. Awọn ẹgbẹ onirokuro yii, nipa siso wipe a wu iwa aiṣododo si wọn, ri ikaanu ọpọ awọn eniyan, bi o si ti saba maa n ṣẹlẹ si awọn ti n ṣe ohun ti ko tọ, a ri wọn gẹgẹ bi ajẹriku. Bayi ni a ṣe ikaanu fun awọn ti wọn n lo gbogbo agbara lati tako iṣẹ Atunṣe, ti a si n gboriyin fun wọn gẹgẹ bi awọn ti n jiya iwa ika ati ipalara. Iṣẹ Satani niyii, iru ẹmi iṣọtẹ kan naa ti a fihan ni ọrun naa ni o n lo wọn.

Satani n ṣiṣẹ nigba gbogbo lati tan awọn eniyan jẹ ki o si jẹ ki wọn o pe ẹṣẹ ni ododo, ati ododo ni ẹṣẹ. Iṣẹ rẹ ti saba maa n ṣe aṣeyọri to! Ọpọ igba ni a maa n ṣe ibawi, ti a si n kẹgan awọn iranṣẹ Ọlọrun tootọ nitori ti wọn fi igboya duro ti otitọ! A wa n yin awọn iranṣẹ Satani, a tun sọ ọrọ didun si wọn, ani a maa n wo wọn bi ajẹriku, nigba ti a a wa fi awọn ti o yẹ ki a bọwọ fun ki a tun ran lọwọ nitori iṣotitọ wọn si Ọlọrun silẹ lati duro ni awọn nikan labẹ ifunra si ati aifọkantan.

Iwa mimọ ayederu, isọdimimọ eke si n ṣe iṣẹ itanjẹ rẹ. Ni orisirisi ọna ni o gba n fi iru ẹmi kan naa han gẹgẹ bi o ti ṣe ni akoko Luther, o n yi ọkan awọn eniyan kuro ninu Iwe Mimọ o si n dari wọn lati tẹle ifẹ ati ero inu ara wọn dipo ki wọn ṣe igbọran si ofin Ọlọrun. Ọkan lara awọn ọna ti o n ṣiṣẹ julọ, ti o maa n lo lati ko ẹgan ba iwa mimọ ati otitọ niyii.

Luther gbeja iyinrere ninu gbogbo atako ti o wa ni ibi gbogbo laibẹru. Ọrọ Ọlọrun fi ara rẹ han gẹgẹ bi ohun ija ti o lagbara ninu gbogbo ija. O ba aṣẹ ti popu fi ipa gba, ati ero ijinlẹ eniyan ti awọn ọmọwe fi n kọni ja pẹlu ọrọ naa, nigba ti o duro gbọin bi apata ni atako si erokero ẹsin ti o fẹ so ara rẹ pọ mọ iṣẹ Atunṣe.

Olukuluku awọn ikọni alatako wọnyi ni wọn n gbe Iwe Mimọ ti si ẹgbẹ kan ni aaye wọn ti wọn si n gbe ọgbọn eniyan ga gẹgẹ bi orisun otitọ ẹsin ati imọ. Ọgbọn inu eniyan sọ iṣọwọronu eniyan di orisa, o si fi eyi ṣe ofin fun ẹsin. Ẹsin Romu, nipa fifun popu rẹ ni imisi ti o wa laisi iyapa lati ọdọ awọn apostoli, ti ko si le yẹ titi lae, fi aaye nla silẹ fun gbogbo aṣeju ati iwa ibajẹ ti a o si fi wọn pamọ si abẹ iwa mimọ aṣẹ awọn apostoli. Imisi ti Munzer ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ sọ wipe awọn ni kò ti ibi kankan wa ju inu ero ọkan wọn lọ, ipa rẹ ko si ni jẹ ki

eniyan o tẹriba fun aṣẹ kankan, i baa jẹ ti eniyan tabi ti Ọlọrun. Ẹsin Kristẹni tootọ n gba ọrọ Ọlọrun gẹgẹ bi ile iṣura nla ti o kun fun awọn otitọ ti a mi si, ati ohun ti a le fi dan gbogbo imisi wo.

Nigba ti o kuro ni Wartburg, Luther pari iṣẹ itumọ rẹ lori Majẹmu Tuntun, a si fi iyinrere fun awọn eniyan ilẹ Germany ni ede abinibi wọn laipẹ jọjọ. Gbogbo awọn ti wọn fẹran otitọ ni wọn fi ayọ nla gba itumọ yii; ṣugbọn awọn ti wọn yan aṣa ati ofin eniyan fi ẹgan kọ ọ silẹ.

Ẹru ba awọn alufa nitori pe awọn eniyan lasan yoo le ba wọn ṣe ijiroro lori ẹkọ ọrọ Ọlọrun, ti a yoo si fi aimọkan wọn han. Agbara ohun ija ẹran ara ti wọn ni ko ni agbara lati tako ida Ẹmi. Romu lo gbogbo agbara rẹ lati le dena pinpin Iwe Mimọ kaakiri; ṣugbọn awọn aṣẹ, egun, ati ijiya ja si asan papọ. Bi o ti n fi ofin de Bibeli si, bẹẹ ni ifẹ awọn eniyan lati mọ ohun ti o n kọni gan an n pọ si. Gbogbo awọn ti wọn le kawe ni wọn fẹ lati kẹkọ ọrọ Ọlọrun funra wọn. Wọn n gbe kaakiri pẹlu ara wọn, wọn si n ka a ni akatunka, ko si tẹ wọn lọrun titi ti wọn fi ko abala pupọ ninu rọ sori. Nigba ti o ri ifẹ ti awọn eniyan fi gba Majẹmu Tuntun, loju ẹṣẹ, o bẹrẹ si ni i ṣe itumọ Majẹmu Laelae, o si n tẹ ẹ jade, bi o ti n pari wọn labalalabala.

Ati ninu ilu, ati ninu abule ni a ti fi tayọtayọ gba awọn iwe Luther. “Ohun ti Luther ati awọn ọrẹ rẹ n kọ silẹ, awọn miran n pin kaakiri. Awọn ajẹẹjẹ ẹsin ti oye ti ye nipa bi awọn ilana igbe aye ẹsin ko ti bofin mu to, ti wọn n fẹ lati gbe igbesi aye iṣẹ ju igbesi aye alainiṣẹ ti wọn n gbe lọ, ṣugbọn ti wọn ko le polongo ọrọ Ọlọrun nitori aimọkan wọn, n rin kaakiri gbogbo ipinlẹ, wọn n bẹ awọn ahéré ati ileto wo, nibi ti wọn n ta awọn iwe Luther ati ti awọn ọrẹ rẹ si. Laipẹ jọjọ, ilẹ Germany kun fun awọn ọtawe onigboya wọnyi.”

Awọn eniyan, ati ọlọrọ, ati otoṣi, ati ọmọwe ati alaimọkan ni wọn n kẹkọ awọn ikọni wọnyi pẹlu ifẹ ọkan ti o lagbara. Ni aṣalẹ, awọn olukọ ile ẹkọ ni awọn abule yoo maa ka wọn soke si awọn ẹgbẹ ti wọn ba pejọ pọ si ẹgbẹ iná. Pẹlu gbogbo agbara, awọn ọkan yoo gbagbọ ninu otitọ, wọn yoo si gba ọrọ naa pẹlu ayọ, wọn a tun lọ sọ iroyin ayọ naa fun awọn miran.

Awọn ọrọ Imisi wa si imuṣẹ: “Iwọle ọrọ Rẹ n funni ni imọlẹ; o n fi oye fun òpè.” O. Dafidi 119:130. Ẹkọ ọrọ Ọlọrun n ṣe awọn ayipada nla ni ọkan ati iye awọn eniyan. Iṣakoso popu gbe ajaga irin si ori awọn atẹle rẹ, o si de wọn mọ inu aimọkan ati abuku. Awọn eniyan n fi tọkantọkan tẹle awọn ilana rẹ pẹlu aimọkan; ṣugbọn ninu gbogbo isin wọn, ọkan wọn ati ironu wọn kò kó ipa pupọ. Iwaasu Luther fi awọn otitọ ọrọ Ọlọrun ti o yè kooro han, ọrọ naa funra rẹ ni ọwọ awọn eniyan lasan, sọ agbara wọn ti o ti sun ji, ki i ṣe wipe o sọ igbesi

aye ẹmi wọn di mimọ ati pataki nikan, ṣugbọn o fi okun ati agbara tuntun kun inu oye wọn.

Gbogbo eniyan ni wọn gbe Bibeli lọwọ, wọn si n wi awijare fun awọn ikọni iṣẹ Atunṣe. Awọn atẹle popu ti wọn ti fi ẹkọ Bibeli silẹ fun awọn alufa ati awọn ajẹjẹ ẹsin wa n pe wọn lati jade wa lati tako awọn ikọni tuntun wọnyi. Ṣugbọn nitori ti wọn jẹ alaimọkan ninu Iwe Mimọ ati nipa agbara Ọlọrun, awọn alufa ati awọn ajẹjẹ ẹsin maa n ri ibaku patapata niwaju awọn ti wọn da lẹbi gẹgẹ bi alaimọkan ati ẹlẹko odi. Onkọwe ọmọ ijọ Katoliki kan sọ wipe, "O ṣeni laanu wipe Luther ti rọ awọn atẹle rẹ lati maṣe ni igbagbọ ninu ohunkohun mọ ayafi Iwe Mimọ." Ọpọ eniyan yoo pejọ pọ lati gbọ otitọ ti awọn eniyan ti kò mọwe pupọ n sọ, ani wọn tun n ṣe ijiroro pẹlu awọn ọmọwe ati awọn ti n kọ nipa Ọlọrun ti ẹnu wọn ja fafa. Aimọkan onitiju awọn eniyan nla wọnyi ni a maa n fihan nigba ti a ba fi otitọ ọrọ Ọlọrun pade awọn ironu wọn. Awọn oṣiṣẹ, jagunjagun, obinrin, ani awọn ọmọde ni imọ awọn ikọni Bibeli ju awọn alufa ati awọn ọmọwe lọ.

Iyatọ ti o wa laarin awọn ọmọlẹyin iyinrere ati atẹle eke popu fi ara han laarin awọn ọmọwe gẹgẹ bi o ti fi ara han laarin awọn eniyan lasan. "Ni atako si awọn ti wọn tẹle aṣa ijọ to ti di ogbó ni ti a ri awọn ti wọn kọ ẹkọ ede ati ikọni nipa ohun atijọ silẹ, . . . awọn ọdọ ti iyè wọn ja fafa fi ara wọn jin fun ẹkọ, wọn n yẹ Iwe Mimọ wo, wọn si n ni oye eyi ti o ṣeyebiye julọ ninu awọn ohun igba atijọ. Wọn ni oye ti o yè kooro, ẹmi ti o dagba soke, ati ọkan ti o gboya, laipẹ jọjọ, awọn ọdọ wọnyi ni imọ to bẹẹ gẹẹ ti o fi jẹ wipe ko si ẹni ti o ba wọn figagbaga fun igba pipẹ. . . . Ni ọna kan naa, nigba ti awọn ọdọ agbeja iṣẹ Atunṣe wọnyi ba pade awọn ọmọwe ẹlẹsin Romu ninu apero, wọn a ṣe atako wọn pẹlu irọrun ati igboya ti o fi jẹ wipe awọn alaimọkan eniyan wọnyi a lọra, oju a ti wọn, gbogbo eniyan a si fi oju tẹnbẹlu wọn."

Bi awọn alufa ẹsin Romu ti n ri wipe awọn ọmọ ijọ wọn n din ku, wọn beere fun iranlọwọ awọn alaṣe ilu, wọn si lo ohun gbogbo ti o wa ni ikawọ wọn lati le da awọn olugbọ wọn pada. Ṣugbọn awọn eniyan ti ri ohun ti o tan aini ọkan wọn ninu awọn ikọni tuntun wọnyi, wọn si yi pada kuro ni ọdọ awọn ti wọn ti fi pantiri ẹsin eke ati aṣa eniyan bọ wọn fun igba pipẹ.

Nigba ti a ba dana inunibini si awọn olukọ otitọ, wọn mu ọrọ Kristi lo, eyi ti o wipe: "Nigba ti wọn ba ṣe inunibini si yin ninu ilu kan, ẹ lọ si ibomiran." Matiu 10:23. Imọlẹ naa tan de ibi gbogbo. Awọn ti a n le kiri n ri awọn olugbalejo kan ti yoo gba wọn sile, wọn a gbe nibẹ, wọn a si waasu Kristi, ni igba miran ninu ile ijọsin, tabi, bi a ko ba fun

wọn ni anfani yii, ninu ile awọn eniyan, tabi ni ita gbangba. Nibikibi ti wọn ba ti ni olugbọ ni wọn sọ di tẹmpili mimọ. Otitọ naa, ti a fi iru agbara ati idaniloju yii waasu rẹ, tan kaakiri pẹlu agbara ti a ko le koju.

Lasan ni awọn alaṣẹ ilu ati ti ijọ ṣiṣẹ lati fa ekọ odi yii tu. Lasan ni wọn lo ọgba ẹwọn, ifiyajẹni, ina, ati ida. Ẹgbẹẹgbẹrun awọn onigbagbọ ni wọn fi ẹjẹ ara wọn ṣe edidi igbagbọ wọn, sibẹ iṣẹ wọn n tẹsiwaju. Inunibini n ṣiṣẹ lati tan otitọ naa kalẹ si ni, bẹẹ si ni erokero ti Satani n ṣe akitiyan lati dapọ pẹlu rẹ ṣiṣẹ lati fi iyatọ ti o wa laarin iṣẹ Satani ati iṣẹ Ọlọrun han kedere ni.

11

Awọn Ijoye Fi Ẹhonu Han

Ọkan lara ijẹri to ṣe pataki julọ ti a ṣe fun iṣẹ Atunṣe ni ifẹhonu han ti awọn ijoye ti n ṣe ẹsin Kristẹni ni ilẹ Germany fihan ninu igbimọ ti Spires ni 1529. Igboya, igbagbọ, ati iduroṣinṣin awọn eniyan Ọlọrun wọnyi gba ominira fun ero inu ati eri ọkan fun awọn iran ti o tẹle. Ifẹhonu han wọn ni o fun ijọ ti a fọ mọ ni orukọ Protestant; awọn agbekalẹ rẹ ni "ipilẹ fun ẹsin Protestant."

Igba okunkun to lẹru de fun iṣẹ Atunṣe. Yato si aṣẹ Worms ti o yọ Luther kuro labẹ aabo ofin, ti o si tako awọn ikọni tabi igbagbọ rẹ, ifarada ẹsin ti n gbilẹ ninu ijọba naa. Agbara Ọlọrun da awọn agbara ti n tako otitọ duro. Charles V n fẹ lati pa iṣẹ Atunṣe run, ṣugbọn nigbakugba ti o ba gbe ọwọ rẹ soke, o maa n di dandan fun lati yi ọwọ rẹ pada. Latigbadegba ni o dabi ẹnipe iparun kiakia yoo kọlu gbogbo awọn ti wọn gboya lati tako Romu; ṣugbọn ni akoko ti o nira julọ, awọn ọmọ ogun Turk yọ lati iha ila oorun wa, ṣugbọn ọba France, ati popu funra rẹ ko ogun ja a nitori ti wọn jowu wipe agbara ọba naa n tubọ n pọ si; nitori eyi, laarin ija ati rogbodiyan awọn orilẹ ede, a fi iṣẹ Atunṣe silẹ lati dagba ati lati tan kalẹ.

Amọ lẹyin-ọrẹyin, awọn ilẹ ti n ṣe atilẹyin popu pari ija wọn ki wọn baa le jumọ pọ ṣe atako awọn Alatunṣe. Igbimọ Spires ni 1526 ti fun ipinlẹ kọọkan ni ominira ninu ọrọ ti o ba ni i ṣe pẹlu ẹsin titi a yoo fi pe ipade apapọ; ṣugbọn kopẹ pupọ nigba ti ewu ti o fa ipinu yii kọja, ti ọba pe igbimọ keji lati pade ni Spires, lati le pa ẹkọ odi run. Bi o ba ṣe e ṣe a yoo fi ọna alaafia fa oju awọn ijoye mọra lati le tako iṣẹ Atunṣe; ṣugbọn bi eyi ba baku, Charles ṣetan lati lo idà.

Inu awọn atẹle popu dun. Awọn tó wa si Spires ninu wọn pọ jọjọ, wọn si fi ikorira wọn han si awọn Alatunṣe ati awọn ti wọn ṣe ti wọn ni ojutaye. Melancthon sọ wipe: “Awa ni ohun ifibu ati idọti aye; ṣugbọn Kristi yoo boju wo awọn otoṣi eniyan rẹ, yoo si pa wọn mọ.” A ko gba awọn ijoye inu igbimọ naa ti wọn gbagbọ ninu iyinrere laaye lati waasu iyinrere ninu ibugbe wọn. Ṣugbọn awọn ara Spires n poungbẹ fun ọrọ Ọlọrun, pẹlu gbogbo awọn ofin ti wọn ṣe, ọpọ awọn eniyan ni wọn lọ si ibi isin ti a ṣe ninu ile ijọsin afọbajẹ ti Saxony.

Eyi tete mu wahala wá kankan. A ka iṣẹ iranṣẹ ọba ninu igbimọ naa wipe bi a ti fun ni ni ominira ti ẹri ọkan ti fa rukerudo nla, ọba si fẹ ki a fagile. Aṣẹ ti ko si idi fun yii fa ibinu ati ibẹru laarin awọn Kristẹni ti wọn gbagbọ ninu iyinrere. Ọkan sọ wipe: “Kristi titun ṣubu si ọwọ Kaifa ati Pilatu.” Iwa ipa awọn ẹlesin Romu tubọ n pọ si. Onitara alaimoye atẹle popu kan sọ wipe: “Awọn ara Turks san ju awọn atẹle Luther lọ; nitori ti awọn ara Turks ni ọjọ ti wọn n gbawẹ, ṣugbọn awọn atẹle Luther ki i ṣe bẹẹ. Bi a ba nilati yan laarin Iwe Mimọ Ọlọrun ati awọn aṣiṣe ti wọn ti pẹ ninu ijọ, a nilati kọ ọrọ Ọlọrun silẹ.” Melancthon sọ wipe: “Faber n sọ okuta tuntun si awa ti o gbagbọ ninu iyinrere lojoojumọ, laarin awọn eniyan inu apero.”

A ti gbe ifarada ẹsin kalẹ ni ọna ti o ba ofin mu, awọn ipinlẹ ti wọn gbagbọ ninu iyinrere si pinu lati tako titapa si ẹtọ wọn. Luther, ko le lọ si Spires nitori ti o si wa labẹ ihamọ ti Aṣẹ Worms fi si; ṣugbọn awọn alabaṣiṣẹpọ rẹ, ati awọn ijoye ti Ọlọrun gbe dide lati gbeja iṣẹ Rẹ ni akoko pajawiri yii rọpọ rẹ. Frederick, ẹni pataki, ẹni ti o n daabo bo Luther tẹlẹ ti ku; ṣugbọn Duke John, arakunrin rẹ, ati ẹni ti o rọpo rẹ fi tayọtayọ gba iṣẹ Atunṣe, o fẹran alaafia, ṣugbọn o fi agbara ati igboya han ninu ohun gbogbo ti o ba ni i ṣe pẹlu igbagbọ.

Awọn alufa beere wipe ki awọn ipinlẹ ti wọn gba iṣẹ Atunṣe o gba aṣẹ Romu laisi ibeere. Awọn Alatunṣe, ni ọna keji, n beere fun ominira ti a ti kọkọ fifun ni. Wọn ko le fi ọwọ si ki Romu tun da awọn ipinlẹ ti wọn ti fi ayọ nla gba ọrọ Ọlọrun pada si abẹ akoso rẹ.

Lati le ni alaafia, ẹnikan sọ wipe nibi ti iṣẹ Atunṣe ko ba ti fi ẹsẹ mulẹ, ki a fi agbara nla fun Aṣẹ Worms lokun nibẹ; ati pe, “nibi ti awọn eniyan ba ti yapa kuro ninu rẹ, bi a ba ni ki wọn wa ni ibamu pẹlu rẹ ti o le fa rogbodiyan, ki wọn maṣe atunṣe tuntun, ki wọn ma sọrọ lori ohunkohun ti o le fa ede aiyede, wọn ko gbodo tako gbigba mass, wọn ko si gbọdọ gba ki awọn ẹlẹsin Katoliki ti Romu o darapọ mọ ẹsin Luther.” A gbe aba yii kalẹ niwaju igbimọ, o si tẹ awọn alufa ati bisọbu popu lọrun daradara.

Bi a ba fi ọwọ si aṣẹ yii, “Iṣẹ Atunṣe ko nile tan kalẹ . . . de ibi ti a ko ti mọ ọ, bẹẹ si ni a ko nile fi ẹsẹ rẹ mulẹ lori ipilẹ ti o lagbara . . . ni awọn ibi ti o wa.” Ko ni si ominira lati sọrọ. Ko ni si aaye fun ijere ọkan. A si fẹ ki awọn ọrẹ iṣẹ Atunṣe o faramọ idiloowọ ati ìfòfindè yii. O dabi ẹnipe ireti aye ti fẹ wọ omi. “Fifi idi aṣẹ Romu mulẹ pada . . . yoo da awọn aṣeju atijọ pada laiyẹsẹ;” àáyè yoo si wa daradara lati “pari iparun” iṣẹ ti “iyapa ati erokero ẹsin ti mì jìgìjigi.”

Bi awọn ẹgbẹ ti wọn gbagbọ ninu iyinrere ti pade fun ijiroro, wọn wo ara wọn pẹlu ifoya. Wọn n beere lọwọ ara wọn wipe: “Kini ki a ṣe?” Awọn ọrọ nla ti o kan gbogbo aye ni o wa nilẹ. “Ṣe ki awọn adari iṣẹ Atunṣe o tẹriba, ki wọn si gba aṣẹ naa ni? Bawo ni o ṣe rọrun to fun awọn Alatunṣe lati ṣe aroye titi ti wọn a fi ṣe ohun ti ko tọ ni akoko wahala yii, bi o tilẹ jẹ wipe o tobi nitootọ! Awọn idi ti ko tọna ṣugbọn ti wọn dara loju ti pọ to fun wọn lati gba a! A fun awọn ijoye ti wọn jẹ atẹle Luther ni anfani lati ṣe ẹsin wọn laisi idiwọ. A fun gbogbo awọn ọmọ ijọba wọn ti wọn ti gba igbagbọ yii ṣaaju ki a to ṣe ofin yii ni iru anfani kan naa. Ṣe ko yẹ ki eyi o to wọn bi? Ọpọlọpọ idamu ti gbigba aṣẹ yii i ba dena ti pọ to! Iru ewu ati wahala ti wọn ko mọ wo ni ṣiṣe atako yoo sọ wọn si! Tani o mọ awọn anfani ti ọjọ ọla yoo mu wa? Ẹ jẹ ki a gba alaafia laaye; ẹ jẹ ki a gba ipe alaafia ti Romu n mu wa, ki a si wo ọgbẹ ilẹ Germany san. Awọn Alatunṣe le fi iru awọn ọrọ bawọnyii da ara wọn lare lati gba àbá ti i ba bi iṣẹ wọn ṣubu laipẹ jọjọ.

“Wọn fi tayọtayọ wo ipilẹ ti àbá yii duro le lori, wọn si wuwa pẹlu igbagbọ. Kini ipilẹ naa? Ohun ni ẹtọ Romu lati ṣe akoso ẹri ọkan eniyan ati lati maṣe fi aaye gba iwadi. Ṣebi awọn ati awọn ọmọ ilu wọn yoo jẹgbadun ominira ẹsin? Bẹẹni, ṣugbọn aba yii fun wọn gẹgẹ bi ojurere ni, ki i ṣe gẹgẹ bi ẹtọ. Ilana nla fun aṣẹ yii ni yoo ṣe akoso fun gbogbo awọn ti ko si labẹ agbekalẹ yii; ko si ohun ti n jẹ ẹri ọkan; Romu ni adajọ ti ko le baku, a si nilati ṣe igbọran si i. Gbigba aba yii yoo tumọ si wipe wọn fi ọwọ si ki ominira ẹsin o maṣe koja Saxony ti a ti fọmọ; ninu awọn ilẹ ti n ṣe ẹsin Kristẹni yoku, bibeere ibeere pẹlu ominira ati gbigba igbagbọ ti a fọ mọ yoo jẹ iwa ọdaran, ti a si nilati ṣe idajọ rẹ pẹlu tubu tabi idanasunni. Ṣe wọn yoo gba lati ni agbegbe ti yoo maa ni ominira ẹsin? ki a sọ wipe iṣẹ Atunṣe ti ṣe ijere ọkan rẹ ti o kẹyin? o ti gba ilẹ rẹ ti o kẹyin? ati nibikibi ti Romu ba ti n ṣe akoso lọwọlọwọ, ijọba rẹ yoo wa titi lae? Ṣe awọn Alatunṣe le gba wipe wọn jẹ alailẹṣẹ fun ẹjẹ ọpọ awọn eniyan ti wọn ti padanu ẹmi wọn ninu awọn ilẹ ti n ṣe ẹsin popu nitori wipe wọn fẹ gba ilana yii? Eyi yoo tumọ si wipe, ni akoko ti o ga julọ, wọn kọ iṣẹ iyinrere ati ominira ẹsin Kristẹni silẹ.” Ṣugbọn dipo bẹẹ, wọn yan lati “padanu ohun gbogbo, ani ipinlẹ wọn, ade wọn, ati ẹmi wọn.”

Awọn ijoye sọ wipe, “ẹ jẹ ki a tako aṣẹ yii.” “Lori ọrọ ẹri ọkan, ọpọ eniyan ko ni agbara.” Awọn ijoye sọ wipe: “Aṣẹ 1526 ni o jẹ ki a ri alaafia ti ijọba yii n jẹgbadun rẹ; bi a ba mu kuro, yoo jẹ ki wahala ati iyapa o kun ilẹ Germany. Igbimọ yii ko ni agbara ju lati daabo bo ominira ẹsin lọ titi ti igbimọ ijọ yoo fi pade.” Ojuṣe ilu ni lati daabo bo ominira ẹri ọkan, eyi si ni opin aṣẹ rẹ lori ọrọ ẹsin. Gbogbo ijọba aye ti o ba ṣe ofin tabi ṣe akoso lori iṣẹ ẹsin pẹlu aṣẹ ilu sọ igbagbọ ti awọn Kristẹni ti wọn gbagbọ ninu iyinrere fi gbogbo agbara ja fun nu.

Awọn atẹle popu pinu lati sẹ ohun ti wọn pe ni “agidi ailẹru” yii rọ. Wọn bẹrẹ nipa dida iyapa silẹ laarin awọn alatilẹyin iṣẹ Atunṣe, ati lati ṣẹru ba awọn ti wọn koi tii ṣe atilẹyin rẹ ni gbangba. Lẹyin-ọrẹyin, a pe awọn aṣoju awọn ilu ti wọn ti gba ominira wa siwaju igbimọ a si beere boya wọn yoo gba aba ti wọn mu wa. Wọn bẹbẹ fun akoko diẹ, ṣugbọn a ko fi aaye gba wọn. Nigba ti a beere ni ọwọ wọn, awọn ti wọn duro ti awọn Alatunṣe fẹrẹ to idaji iye wọn. Awọn ti wọn kọ lati kọ ominira ẹri ọkan ati ẹtọ olukuluku lati ṣe ipinu ara rẹ silẹ mọ wipe ipinu wọn ti yà wọn sọtọ fun ẹgan, ibawi, ati inunibini. Ọkan ninu awọn aṣoju naa sọ wipe: “A nilati sẹ ọrọ Ọlọrun tabi—ki a sun wa nina.”

Ọba Ferdinad, aṣoju ọba ninu igbimọ naa ri wipe aṣẹ naa yoo fa iyapa nla ayafi bi a ba le rọ awọn ijoye lati gba a ki wọn si ti i lẹyin. Nitori naa, o wa n rọ wọn, nitori ti o mọ daju wipe fifi ipa mu awọn eniyan wọnyi yoo tubọ jẹ ki wọn lo agidi si ni. O “bẹ awọn ijoye lati gba aṣẹ naa, o fi da wọn loju wipe inu ọba yoo dun si wọn jọjọ.” Ṣugbọn awọn olootọ eniyan wọnyi mọ aṣẹ kan ti o ga ju awọn alaṣe aye lọ, wọn fi tọwọtọwọ dahun wipe: “A yoo ṣe igbọran si ọba ninu ohun gbogbo ti yoo mu alaafia wa, ti yoo si fi ọwọ fun Ọlọrun.”

Niwaju igbimọ naa, ọba kede fun afọbajẹ ati awọn ọrẹ rẹ wipe “a ti fẹ kọ aba naa bi aṣẹ ọba,” ati wipe “ohun ti o ku fun wọn lati ṣe ni lati gba ipinu ọpọ eniyan.” Nigba ti o sọrọ bayii tan, o kuro ninu apero naa ko si fun awọn Alatunṣe ni anfani lati ṣe ijiroro, tabi lati fesi. “Wọn ran aṣoju lati lọ bẹ ọba lati pada wa, ṣugbọn pabo ni o jasi.” Èsì ti o fọ fun gbogbo arọwa ti wọn pa si ni wipe: “A ti ṣe ipinu lori ọrọ naa; ohun ti o ku ni ki a ṣe igbọran si.”

Awọn ti wọn ṣe ti ọba mọ daju wipe awọn ijoye ti wọn jẹ Kristẹni yoo tẹle Iwe Mimọ gẹgẹ bi aṣẹ ti o ga ju ikọni ati ilana eniyan lọ; wọn si mọ wipe, nibikibi ti a ba ti gba ikọni yii, ilana popu yoo ṣubu ni dandan. Ṣugbọn, bi ọpọlọpọ lati akoko yẹn wa, wọn n wo “awọn ohun ti a ri” wọn n dun ara wọn ninu wipe iṣẹ ọba ati ti popu lagbara, titi awọn Alatunṣe si jẹ alailera. Bi o ba jẹ wipe agbara eniyan nikan ni awọn Alatunṣe gbẹkẹle ni, wọn i ba jẹ alailagbara bi awọn atẹle popu ti ro. Ṣugbọn bi o tilẹ jẹ wipe wọn kere niye, ti wọn ko si ba Romu

fi ohun ṣọkan, wọn ni okun wọn. Wọn pe ẹjọ kotẹmilọrun “lati ọdọ iroyin igbimọ lọ si ọdọ ọrọ Ọlọrun, ati lati ọdọ ọba Charles lọ si ọdọ Jesu Kristi Ọba awọn ọba ati Oluwa awọn oluwa.”

Bi Ferdinand ti kọ lati bọwọ fun ohun ti wọn fi tọkantọkan gbagbọ, awọn ijoye naa pinu lati maṣe naani aisinile rẹ, ṣugbọn wọn mu Ifẹhonu han wọn wa siwaju igbimọ orilẹ ede laidẹṣẹduro. Wọn ṣe awọn akọsilẹ pataki kan ti wọn mu wa siwaju igbimọ:

“Awa ti a wa nibi fi èhonu wa han niwaju Ọlọrun, Ẹlẹda, Oludaabobo, Olurapada, ati Olugbala wa kan ṣoṣo, ati Ẹni ti yoo jẹ Adajọ wa ni ọjọ kan, ati niwaju gbogbo eniyan ati gbogbo ẹda, fun awa ati fun awọn eniyan wa, wipe a ko fi ọwọ si tabi faramọ aṣẹ ti a fẹ gbe kalẹ lọnakọna, ninu ohunkohun ti o ba tako Ọlọrun, ọrọ mimọ Rẹ, ẹtọ wa si ẹri ọkan wa, ati si igbala ọkan wa.”

“Kini! A fi ohun si aṣẹ yii! A sọ wipe nigba ti Ọlọrun Alagbara ba pe eniyan wa sinu imọ Rẹ, ẹni naa ko le gba imọ Ọlọrun!” “Ko si ikọni ti o daju ayafi eyi ti o ba ọrọ Ọlọrun mu. . . . Oluwa ko fi ọwọ si kikọ ikọni miran. . . . Awọn ẹsẹ miran ti wọn fi ara han kedere ni o yẹ ki wọn ṣe alaye Iwe Mimọ; . . . Kristẹni nilo Iwe Mimọ yii ninu ohun gbogbo, o rọrun lati yeni, a si fun ni lati le fọn okunkun ká. A ti pinu pẹlu oore ọfẹ Ọlọrun lati ṣe atilẹyin wiwaasu ọrọ Rẹ nikanṣoṣo ninu iwa mimọ rẹ, gẹgẹ bi o ti wa ninu Majẹmu Laelae ati Tuntun, laifi ohun kankan ti o le tako o kun. Ọrọ yii ni otitọ kan ṣoṣo; ohun ni odiwọn ti o daju fun gbogbo ikọni ati igbe aye ti ko le baku, ti ko si le tan wa jẹ. Ẹnikẹni ti o ba kọle le ori ipilẹ yii yoo duro lati doju kọ gbogbo agbara ipo oku, nigba ti gbogbo asan eniyan ti wọn doju kọ ọ yoo ṣubu niwaju Ọlọrun.”

“Nitori idi eyi a kọ ajaga ti wọn gbe si ọrun wa silẹ.” Bakan naa, a n reti ki ọba alayeluwa o ṣe si wa gẹgẹ bi ijoye Kristẹni ti o fẹran Ọlọrun ju ohun gbogbo lọ; a tun sọ wipe a ṣetan lati fun, ati ẹyin oluwa oloore ọfẹ pẹlu, gbogbo ifẹ ati igbọran ti i ṣe ojuṣe wa ti o tọna ti o si ba ofin mu.”

O fi ọwọ ba awọn ọmọ igbimọ lọkan gan an ni. Ọpọ awọn ti wọn wa nibẹ kun fun iyalẹnu ati ibẹru nitori igboya awọn ti n fi ẹhonu han yii. Ọjọ iwaju ko daju, o si ṣokunkun. O dabi ẹnipe iyapa, ija, ati itajẹsilẹ de tan. Ṣugbọn awọn Alatunṣe ni idaniloju wipe iṣe wọn jẹ otitọ, wọn gbẹkẹle ọwọ Alagbara julọ, wọn si “kun fun igboya ati iduro ṣinṣin.”

“Awọn ẹkọ to wa ninu Ifẹhonu han olokiki yii . . . ni i ṣe ipilẹ ẹsin Protestant. Ifẹhonu han yii tako aṣeju meji lori ọrọ igbagbọ: akọkọ ni ayọjuran awọn alaṣe ilu, ekeji si ni agbara ijọ ti a ko gbọdọ wo loju. Dipo awọn aṣeju wọnyi, ẹsin Protestant gbe agbara ẹri ọkan ga ju awọn alaṣẹ ilu lọ, ati aṣẹ ọrọ Ọlọrun ga ju ijọ lọ. Ni akọkọ, o tako

agbara oṣelu ninu ohun ti i ṣe ti ẹmi, o sọ pẹlu awọn woli ati apostoli wipe, 'A nilati gbọ ti Ọlọrun ju ti eniyan lọ.' Niwaju ade Charles Karun, o gbe ade Jesu Kristi ga. Ṣugbọn o ṣe ju eyi lọ; o fi ikọni yii lelẹ wipe gbogbo ikọni eniyan nilati tẹriba fun ọrọ Ọlọrun. Awọn afẹhonuhan tun kede ẹtọ wọn lati sọ nipa igbagbọ wọn nipa otitọ laisi idiwọ. Ki i ṣe wipe wọn a gbagbọ, ti wọn a tun ṣe igboran nikan, ṣugbọn wọn a tun kọni ni ohun ti ọrọ Ọlọrun sọ, wọn tun tako ẹtọ awọn alufa ati awọn alaṣẹ ilu lati ṣe idiwọ. Ifẹhonuhan ti Spires jẹ ijẹri ti o lagbara ni atako si ainifarada lori ọrọ ẹsin, ti o tun fi idi ẹtọ gbogbo eniyan mulẹ lati jọsin Ọlọrun gẹgẹ bi ẹri ọkan wọn ba ti ṣe sọ.

A ti ṣe ikede naa. A kọ ọ si inu ọkan ọpọlọpọ awọn eniyan ati si inu iwe ọrun nibi ti agbara eniyan kan ko ti le paarẹ. Gbogbo awọn eniyan ilẹ Germany ti wọn gbagbọ ninu iyinrere gba Ifẹhonuhan yii gẹgẹ bi afihan igbagbọ wọn. Awọn eniyan ri ileri fun igba ọtun ti o dara ninu akọsile yii nibi gbogbo. Ọkan lara awọn ijoye sọ fun awọn Afẹhonuhan ti Spires wipe: "Ki Ọlọrun Alagbara ti O ti fun yin ni oore ọfẹ lati fi gbogbo agbara ṣe ijẹwọ, laisi idiwọ, ati laibẹru o payin mọ ninu iduroṣinṣin Kristẹni naa titi di ọjọ ailopin."

Bi o ba ṣe wipe lẹyin igba ti o ṣe aṣeyọri diẹ, iṣẹ Atunṣe gba lati wa ojurere aye ni, i ba jẹ alaisootọ si Ọlọrun ati si ara rẹ, i ba si pa ara rẹ run. Iriri awọn Alatunṣe pataki wọnyi jẹ ẹkọ fun gbogbo awọn eniyan ti n bọ. Bi Satani ti n ṣiṣẹ lati tako Ọlọrun ati ọrọ Rẹ koi tii yipada; o si tako ki a fi ọrọ Ọlọrun ṣe odiwọn igbesi aye gẹgẹ bi o ti ṣe ni ọrundun kẹrindinlogun. Nisinsinyii, awọn eniyan ti yapa kuro ninu ikọni ati ilana rẹ, a si nilo lati pada si ipilẹ ẹkọ nla ti awọn Protestant — Bibeli, ani Bibeli nikan, gẹgẹ bi odiwọn fun igbagbọ ati iṣe. Satani si n ṣiṣẹ nipasẹ ohun gbogbo ti o le lo lati pa ominira ẹsin run. Agbara ti o tako ẹsin Kristẹni, eyi ti awọn afẹhonu han ti Spires tako wa n ṣiṣẹ nisinsinyii pẹlu agbara tuntun lati fi idi iṣakoso ti o sọnu mulẹ pada. Titẹle ọrọ Ọlọrun laiyẹsẹ ti a fihan ni akoko wahala fun iṣẹ Atunṣe naa ni ireti fun atunṣe lonii.

Ami ewu fi ara han fun awọn Protestant; awọn ami tun fi ara han pẹlu wipe Ọlọrun na ọwọ Rẹ lati daabo bo awọn olootọ. Laarin akoko yii ni "Melancthon yara mu ọrẹ rẹ, Simon Grynaeus, la aarin ilu Spires kọja lọ si odò Rhine, o n sọ fun ki o re odo naa kọja. Ẹnu ya Simon, o wa beere idi ti o fi wuwa bẹẹ. Melancthon sọ wipe, 'Ọkunrin agbalagba kan ti o duro tọwọtọwọ, ṣugbọn ti emi ko mọ fi ara han fun mi, o si sọ wipe laarin iṣẹju diẹ si, Fardinand yoo ran awọn oniṣẹ idajọ lati wa fi aṣẹ ọba mu Grynaeus.'"

Ni ọjọ naa, Faber, ọga ninu awọn ọmọwe ti i ṣe atẹle popu, ti ba Grynaeus lorukọ jẹ ninu iwaasu rẹ; nigba ti o pari, o ba jiroro lori

bi o ti ṣe n gbeja “awọn aṣiṣe onirira kan.” “Faber fi ibinu rẹ pamọ, ṣugbọn lọgan ti o de ọdọ ọba, o gba aṣẹ lati mu ọjọgbọn oniwahala ti Heidelberg. Melancthon ko ṣe iyemeji wipe Ọlọrun gba ọrẹ rẹ silẹ nipa riran ọkan ninu awọn angẹli mimọ Rẹ lati wa ki i nilọ.

“Laimira ni eti bebe odo Rhine, o duro titi ti odo naa fi gba Grynaeus silẹ kuro lọwọ awọn ti n ṣe inunibini si. Nigba ti Melancthon ri i ni odikeji odo, o kigbe wipe, ‘Eh eh, a gba a kuro ni ẹnu awọn ti n poungbẹ fun ẹjẹ alaiṣẹ.’ Nigba ti o pada de ile rẹ, a sọ fun Melancthon wipe nigba ti awọn iranṣẹ ọba n wa Grynaeus, wọn tu gbogbo inu ile naa yẹbẹyẹbẹ lati oke de isalẹ.”

Iṣẹ Atunṣe yoo lokiki si nipa gbigbe wa si iwaju awọn ẹni nla aye. Ọba Ferdinand kọ lati gbọ ti awọn ijoye ti wọn gba iyinrere gbọ; ṣugbọn a yoo fun wọn ni anfani lati ko ẹjọ wọn wa siwaju ọba ati awọn eniyan pataki ninu ijọ ati laarin ilu. Lati le dawọ rogbodiyan ti n yọ ijọba naa lẹnu duro, Charles V, ni ọdun keji lẹyin ifẹhonuhan ni Spires pe igbimọ kan ni Augsburg, o si sọ wipe oun ni yoo dari igbimọ naa. A pe awọn adari Protestant wa sibẹ.

Awọn ewu nla n dún mọ iṣẹ Atunṣe; ṣugbọn awọn ti n kede rẹ si fi iṣẹ wọn le Ọlọrun lọwọ, wọn pinu lati duro ṣinṣin pẹlu iyinrere. Awọn olubadamọran afọbajẹ ti Saxony rọ ọ ki o maṣe fi ara han ninu igbimọ naa. Wọn sọ wipe, ọba fẹ ki awọn ijoye o wa ki o baa le fa wọn sinu panpẹ ni. “N jẹ ki i ṣe fifi ohun gbogbo wewu ni lati lọ de ara ẹni mọ inu ogiri ilu kan pẹlu ọta alagbara?” Ṣugbọn awọn miran fi igboya dahun pe, “Ẹ jẹ ki awọn ijoye o wuwa pẹlu igboya, a yoo si gba iṣẹ Ọlọrun kuro ninu ewu.” Luther sọ wipe, “Ọlọrun jẹ olootọ; ko ni kọ wa silẹ.” Afọbajẹ pẹlu awọn ẹmẹwa rẹ jade, wọn n lọ si Augsburg. Gbogbo wọn ni wọn mọ iru ewu ti o le wu wọn, ọpọlọpọ si n lọ pẹlu oju kikoro ati ọkan wuwo. Ṣugbọn Luther, ẹni ti o sin wọn de Coburg, sọ igbagbọ wọn ti n rì jí nipa kikọ ọrin ti o kọ silẹ ninu irin ajo naa, “Ile iṣọ alagbara ni Ọlọrun wa.” Ọpọ ipaya ni o bọ kuro ninu ọkan wọn, ọpọ ọkan wuwo ni wọn di fifuyẹ, nigba ti wọn gbọ awọn ọrọ amoriya ti o wa ninu rẹ.

Awọn ijoye ti wọn gba igbagbọ ti a tunṣe pinu lati kọ ero wọn silẹ ni ọna ti o han kedere, pẹlu ẹri lati inu Iwe Mimọ wa, ti wọn yoo si gbe kalẹ niwaju igbimọ. Luther, Melancthon ati awọn akẹgbẹ wọn ni a gbe iṣẹ naa fun. Awọn Protestant gba Ijẹwọ yii gẹgẹ bi alaye lori igbagbọ wọn, wọn si parapọ lati kọ orukọ wọn si ara iwe pataki naa. O jẹ akoko ọlọwọ, ati akoko idanwo. Awọn Alatunṣe n ṣe aajo wipe ki a maṣe da iṣẹ wọn papọ mọ ọrọ oṣelu; wọn ro wipe iṣẹ Atunṣe ko gbọdọ lo agbara kankan ayafi eyi ti o ba jade wa lati inu ọrọ Ọlọrun. Nigba ti awọn ijoye Kristẹni n jade wa lati wa kọ orukọ wọn si ara

Ijęwọ yii, Melancthon da wọn duro, o sọ pe: “Iṣẹ awọn olukọni nipa Ọlọrun ati awọn ojiṣẹ Ọlọrun ni lati dàba awọn nnkan wọnyi; ẹ jẹ ki a fi awọn ohun toku silẹ fun aṣẹ awọn alagbara aye.” John ara Saxony fesi wipe, “Ọlọrun majẹ, ki o yọmi silẹ. Mo ti pinu lati ṣe ohun ti o tọna, lai damu ara mi nipa ade mi. Mo fẹ lati ṣe ijęwọ Oluwa. Fila afọbajẹ ati aṣọ igunwa mi ko ṣe iyebiye ni oju mi bii agbelebu Jesu Kristi.” Nigba ti o sọrọ bayii tan, o kọ orukọ rẹ silẹ. Omiran ninu awọn ijoye naa sọ, bi o ti mu ohun ikọwe wipe: “Bi ọla Jesu Kristi Oluwa mi ba fẹ bẹẹ, mo ṣetan . . . lati fi ẹrù ati ẹmi mi silẹ.” O fikun wipe, “Mo yan lati fi awọn eniyan ilu mi ati ipinlẹ mi silẹ, ani ki n fi orilẹ ede baba mi silẹ pẹlu ọpa ni ọwọ, ju ki n gba ikọni miran ju eyi ti o wa ninu ijęwọ yii lọ.” Bi igbagbọ ati igboya awọn eniyan Ọlọrun wọnyi ti ri niyii.

Akoko to lati fi ara han niwaju ọba. Charles V joko lori itẹ rẹ, awọn afọbajẹ, ati awọn ijoye si joko yii ka, o n tẹti si awọn Protestant Alatunṣe. A ka ijęwọ igbagbọ wọn. Ninu apero pataki yii, a gbe otitọ iyinrere kalẹ ni ọna ti o han kedere, a si fi awọn aṣiṣe ijọ padi han. I ba dara bi a ba pe ọjọ naa ni “ọjọ ti o tobi julọ fun iṣẹ Atunṣe, ati ọkan ninu awọn ti wọn logo julọ ninu itan ẹsin Kristẹni ati ti gbogbo eniyan.”

Ṣugbọn ọdun diẹ ni o kọja lati igba ti ajẹjẹ ẹsin ti Wittenberg danikan duro niwaju igbimọ orilẹ ede ni Worms. Ṣugbọn awọn ijoye alagbara ti wọn lokiki julọ ninu ijọba naa ni wọn duro ni ipo rẹ. A ko fi aaye gba Luther lati fi ara han ni Augsburg, ṣugbọn o wa nibẹ pẹlu ọrọ ati adura rẹ. O kọwe wipe, “Inu mi dun pupọpupọ nitori pe mo wa laaye titi di akoko yii, nigba ti awọn olujęwọ olokiki wọnyi gbe Kristi ga nigbangba, ninu iru apero ologo yii.” Bayi ni Iwe Mimọ ṣe wa si imuṣẹ wipe: “Ẹmi yoo sọ nipa awọn ijęri Rẹ . . . niwaju awọn ọba.” O. Dafidi 119:46.

Ni igba aye Pọlu a mu iyinrere ti a titori rẹ fi sinu tubu wa siwaju awọn ijoye ati ẹni giga ilu alagbara naa. Nitori naa ni akoko yii, ohun ti ọba ti sọ wipe a ko gbọdọ waasu rẹ lori pẹpẹ, a wa n kede rẹ ni aafin ọba; ohun ti ọpọlọpọ ro wipe ko yẹ ki awọn iranṣẹ o tẹti si, ohun ni awọn adari ati oluwa ijọba n tẹti si tiyanutiyanu. Awọn ọba ati awọn eniyan nla ni wọn n gbọ, awọn ijoye alade ni wọn n waasu rẹ, otitọ pataki Ọlọrun si ni iwaasu naa. Onkọwe kan sọ wipe, “Lati akoko awọn apostoli wa, koi tii si iṣẹ ti o tobi ju eyi lọ tabi ijęwọ ti niyin ju.”

Biṣọbu ijọ padi kan sọ wipe, “Ohun gbogbo ti awọn atẹle Luther sọ ni o jẹ ootọ; a ko le sẹ. Omiran beere lọwọ Dr Eck wipe, “Njẹ a le fi imọ ti o ye kooro tako ijęwọ ti afọbajẹ ati awọn alatilẹyin rẹ ṣe yii bi?” “Pẹlu akọsilẹ awọn apostoli ati awọn woli— rara!” ni o fi dahun;

“ṣugbọn pẹlu akọsilẹ awọn Baba ijọ ati ti igbimọ—bẹẹni!” Ẹni ti n beere ibeere wa dahun wipe, “O yemi. Awọn atẹle Luther, gẹgẹ bi o ti sọ wa ninu Iwe Mimọ, nigba ti awa wa ni ita rẹ.”

A jeere diẹ lara awọn ijoye Germany sinu igbagbọ ti a fọmọ. Ọba funra rẹ sọ wipe ootọ ni ohun ti awọn Protestant n sọ. A ṣe itumọ Ijẹwọ yii si orişirişi ede a si pin kaakiri gbogbo Europe, ọpọlọpọ awọn eniyan ni wọn si n gba a ni awọn akoko ti o tẹle gẹgẹ bi ohun ti wọn gbagbọ.

Awọn ojiṣẹ Ọlọrun tootọ ko danikan ṣiṣẹ. Nigba ti awọn ijoye ati agbara ati ẹmi buburu ni ibi giga n parapọ lati tako wọn, Oluwa ko fi awọn eniyan Rẹ silẹ. Bi o ba ṣe wipe a ṣi wọn ni oju ni, wọn i ba ri ami iduroti ati iranlọwọ Ọlọrun bi a ti fifun awọn woli ni igba atijọ. Nigba ti iranṣẹ Eliṣa fi awọn ẹgbẹgun ti o yi wọn ka, ti ko si fun wọn ni aaye lati salọ, han Eliṣa, woli naa gbadura: “Oluwa, mo bẹ Ọ, ṣi oju rẹ, ki o le riran.” 2 Awọn Ọba 6:17. Si kiyesii, ori oke naa kun fun kẹkẹ ati ẹṣin ina, ẹgbẹgun ọrun ti a kó sibẹ lati daabo bo eniyan Ọlọrun. Bẹẹ gẹgẹ ni awọn angẹli ṣe daabo bo awọn oṣiṣẹ ninu iṣẹ Atunṣe.

Ọkan lara awọn ikọni ti Luther di mu ṣinṣin ni pe a ko gbọdọ lo agbara ijọba lati ran iṣẹ Atunṣe lọwọ, a ko si ni lo ohun ija lati gbeja rẹ. Inu rẹ dun wipe awọn ijoye inu ijọba naa jẹwọ iyinrere; ṣugbọn nigba ti wọn sọ wipe wọn fẹ darapọ lati daabo bo o, o sọ wipe “Ọlọrun nikan ṣoṣo ni o yẹ ki o daabo bo ẹkọ iyinrere. . . . Bi ipa ti eniyan ba ko ninu rẹ ba ti kere to, bẹẹ ni iṣẹ Ọlọrun nitori rẹ yoo ti pọ to. O ri gbogbo aba iṣọrasẹ oṣelu ti wọn n ṣe gẹgẹ bi ibẹru ti ko yẹ ati ainigbẹkẹle ti o ni ẹṣẹ ninu.”

Nigba ti awọn ọta alagbara parapọ lati doju igbagbọ ti a fọmọ bolẹ, ti o dabi ẹnipe a ti fẹ yọ ọpọlọpọ idà ti i, Luther kọwe wipe: “Satani n fi ibinu rẹ han; awọn alufa alaiwabiọlọrun n ditẹ; ogun si dó tì wa. Ẹ rọ awọn eniyan lati fi igboya jagun niwaju itẹ Ọlọrun, pẹlu igbagbọ ati adura, ki awọn ọta wa le fi agidi duro ni alaafia nigba ti Ẹmi Ọlọrun ba ṣẹgun wọn. Ohun ti a nilo julọ, iṣẹ wa ti o ga julọ ni adura; ẹ jẹ ki awọn eniyan o mọ wipe ida doju kọ wọn, ibinu Satani si n ru si wọn, ẹ si jẹ ki wọn gbadura.”

Nigba ti o n sọ nipa adehun ti awọn ijoye ti wọn gba igbagbọ ti a tunṣe fẹ ṣe ni ọjọsi, Luther sọ wipe ohun ija kan ṣoṣo ti o yẹ ki a lo ninu ija yii ni “ida Ẹmi.” O kọwe si afọbajẹ ti Saxony wipe: “A kole fi ọwọ si ibaṣepọ ti wọn gbero naa nitori ẹri ọkan wa. A yan lati ku ni igba mẹwa ju ki a ri ki a ta ẹjẹ kan silẹ nitori iyinrere wa lọ. Ipa tiwa ni lati dabi ọdọ aguntan ti a fẹ pa. A nilati gbe agbelebu Kristi. Maṣe jẹ ki ẹru o ba alayeluwa rẹ. Adura wa yoo ṣiṣẹ ju gbogbo ohun ti awọn ọta wa yoo ṣe pẹlu ifọnu wọn. Ẹ maṣe jẹ ki ẹjẹ awọn arakunrin yin o

wa ni ọwọ yin. Bi ọba ba fẹ fi wa le igbimọ igbẹjọ rẹ lọwọ, a ṣetan lati fi ara han. O o le gbeja igbagbọ wa: olukuluku ni yoo gbagbọ pẹlu ewu ati wahala fun ara rẹ."

Lati ibi ikọkọ adura ni agbara ti o mi aye ninu iṣẹ Atunṣe Nla ti jade wa. Nibẹ, pẹlu idakẹjẹ mimọ, awọn iranṣẹ Ọlọrun fi ẹsẹ wọn le ori apata awọn ileri Rẹ. Ni akoko wahala ni Augsburg, Luther "ko jẹ ki ọjọ kan o kọja laiṣe wipe o fi wakati mẹta, o kere tan, ninu awọn akoko ti wọn dun un kawe julọ gbadura." Ninu yara rẹ, a gbọ ti o n tu ọkan rẹ jade niwaju Ọlọrun pẹlu awọn ọrọ "ti wọn kun fun iyin, ibẹru, ati ireti, bi igba ti eniyan ba n ba ọrẹ rẹ sọrọ." O sọ wipe, "Mo mọ wipe Iwọ ni Baba ati Ọlọrun wa, Iwọ yoo si fọn awọn ti n ṣe inunibini si awọn ọmọ Rẹ ka; nitori ti ewu n wu Ọ pẹlu wa. Tirẹ ni gbogbo ọrọ naa, nipasẹ agbara Rẹ si ni a fi fi ọwọ wa si. Nitori naa, daabo bo wa o Baba!"

O kọwe si Melancthon ti ibẹru ati ipaya bo mọlẹ bayii pe: "Oore ọfẹ ati alaafia ninu Kristi—ninu Kristi ni mo sọ ki i ṣe ninu aye. Amin. Mo ni ikorira ti o pọ jọjọ si awọn aniyan ti wọn n bo ọ mọlẹ. Bi iṣẹ naa ki i ba n ṣe ti ododo fi silẹ; bi o ba n ṣe ti ododo, kilode ti ko yẹ ki a fi gbagbọ ninu awọn ileri Ẹni ti o paṣẹ fun wa lati sun lai bẹru? . . . A kò lè wá Kristi tì ninu iṣẹ otitọ ati ododo. O wa laaye. O n jọba; iru ibẹru wo ni o wa yẹ ki a ni?"

Ọlọrun gbọ igbe awọn iranṣẹ Rẹ. O fun awọn ijoye ati alufa ni igboya ati oore ọfẹ lati di otitọ mu ni atako si awọn alaṣẹ ibi okunkun aye yii. Oluwa sọ wipe: "Kiyesii, Mo gbe okuta igun ile kan lelẹ ni Sioni, eyi ti a yan ti o si ṣe iyebiye: ẹni ti o ba gbagbọ ninu Rẹ, oju ki yoo ti i." I Peteru 2:6. Awọn Protestant Alatunṣe ti kọle le ori Kristi, ilẹkun ipo oku ko si le bori wọn.

12

Iṣẹ Àtunṣe Ni Orilẹ-Ede France

Awọn akoko ogun ati okunkun ni wọn tẹle ifẹhonuhan ti Spires ati ijẹwọ ni Augsburg, awọn iṣẹlẹ ti wọn jẹ ami iṣẹgun iṣẹ Atunṣe ni Germany. Iyapa laarin awọn atẹle rẹ so ọ di alailagbara, ọta alagbara si n gbéja kò o, o dabi ẹnipe a yoo pa ẹsin Protestant run patapata. Ọpọ awọn eniyan ni wọn fi ẹjẹ wọn ṣe edidi si ijẹri wọn. Ogun abẹle bẹ silẹ; ọkan lara awọn aṣaju ninu ẹsin Protestant tu aṣiri rẹ; ẹni ti o gbayi julọ ninu awọn ijoye ti wọn gba igbagbọ ti a tunṣe ṣubu si ọwọ ọba, o si n wọ lati ilu de ilu bi ẹlẹwọn. Ṣugbọn ni akoko iṣẹgun rẹ yii, ọba ri ijakulẹ. O ri ti a gba ẹlẹwọn rẹ kuro ni ọwọ rẹ, o wa di dandan fun lati ni ifarada fun ikọni ti o jẹ wipe erongba ọjọ aye rẹ ni lati parun. O ti fi ijọba rẹ, ohun ini rẹ, ati ẹmi ara rẹ wewu nitori pe o fẹ pa ẹkọ odi run. O ri pe a ti fi awọn ọmọ ogun rẹ ṣofo ninu ogun, ohun ini rẹ ti gbalọ tan, ọpọ awọn ilẹ ijọba rẹ si n mura lati ṣọtẹ, nigba ti igbagọ ti o n ṣiṣẹ lasan lati parun n tan kalẹ ni ibi gbogbo. Charles V n ba agbara ti o ju gbogbo agbara lọ ja. Ọlọrun ti so wipe, "Jẹ ki imọlẹ ki o wa," ṣugbọn ọba naa ko fẹ ki okunkun o lọ. Ète rẹ baku; o di arugbo laitọjọ, wahala fun igba pipe ti so di ogbó, o fi itẹ silẹ, o lọ ti ara rẹ mọ inu ile awọn ajẹjẹ ẹsin.

Ni Switzerland, gẹgẹ bi o ti ṣẹlẹ ni Germany, awọn akoko okunkun de si iṣẹ Atunṣe. Bi o tilẹ jẹ wipe ọpọ awọn agbegbe ni wọn ti gba igbagbọ ti a tun ṣe, sibẹ awọn miran si fi aimọkan di mọ igbagbọ Romu. Bi wọn ti ṣe inunibini si awọn ti wọn fẹ lati gba otitọ wa yọri si ogun abẹle. Zwingli ati ọpọ awọn ti wọn darapọ mọ ninu iṣẹ atunṣe ni wọn ṣubu ninu ogun gbigbona ti Cappel. Wahala yii pọju fun Oecolampadius, laipẹ o ku. Romu di aṣẹgun, ni ibi pupọ, o dabi

ẹnipe o fẹrẹ ri ohun gbogbo ti o ti padanu gba pada. Ṣugbọn Ẹni ti imọran Rẹ wa lati irandiran ko kọ iṣẹ tabi awọn eniyan Rẹ silẹ. Ọwọ Rẹ yoo fun wọn ni itusilẹ. Ni awọn ibomiran, O n gbe awọn oṣiṣẹ dide lati tẹsiwaju ninu iṣẹ atunṣe naa.

Ṣaaju ki a to gbọ orukọ Luther gẹgẹ bi Alatunṣe, ọjọ ti bẹrẹ si nii yọ ni France. Ọkan lara awọn ti wọn kọkọ ri imọlẹ naa ni Lefevre; o ti di arugbo; o jẹ ẹni ti o kawe gan an, ọjọgbọn ninu ile ẹkọ giga ti Paris, o si jẹ ẹni ti o fi tọkantọkan ati itara tẹlẹ ẹsin popu. Nigba ti o n ṣe iwadi lori awọn iwe igba atijọ, ọkan rẹ lọ si ara Bibeli, o si fihan fun awọn akẹkọ rẹ.

Lefevre jẹ ẹni ti o fi tayọtayọ n jọsin awọn eniyan mimọ, o si mura lati kọ itan awọn eniyan mimọ ati awọn ajẹriku gẹgẹ bi a ti fifunni ninu itan ijọ. Iṣẹ yii nilo wahala pupọ; ṣugbọn o ti ṣe e de ibi ti o ni apẹẹrẹ, nigba ti o ro wipe oun le ri iranlọwọ daradara ninu Bibeli, o bẹrẹ si nii kọ pẹlu ero yii lọkan. O ri awọn eniyan mimọ bi wọn ti ri gan an nibi, ṣugbọn ki i ṣe bi iwe ijọ Romu ti sọ. Imọlẹ ọrun rọ wọ inu iye rẹ. Pẹlu iyalẹnu ati itiju, o yipada kuro ninu iṣẹ ti o fun ara rẹ ṣe yii o si fi ara rẹ jin fun ọrọ Ọlọrun. O bẹrẹ si nii kọni ni awọn otitọ iyebiye ti o ri.

Ni 1512, ṣaaju ki Luther tabi Zwingli to bẹrẹ iṣẹ atunṣe, Lefevre kọwe wipe: “Ọlọrun ni o n fun wa ni ododo naa ti o n dawalare nipa oore ọfẹ nikan ṣoṣo si iye ainipẹkun nipa igbagbọ.” Nigba ti o n ronu lori awọn ohun ijinlẹ irapada, o sọ wipe: “Ah titobi pasiparọ naa ko ṣe e fi ẹnu sọ,—a da Alailẹṣẹ lẹbi ti ẹlẹbi si lọ lọfẹẹ; Ibukun gba egun, a si mu egun wa sinu ibukun; Iye ku, oku si ye; okunkun bo Ogo mọlẹ, ẹni ti ko si mọ ohunkohun ayafi itiju wa ninu ogo.”

Nigba ti o n kọni wipe ogo igbala jẹ ti Ọlọrun nikan ṣoṣo, o tun sọ wipe ojuṣe igbọran jẹ ti eniyan. O sọ wipe, “Bi iwọ ba jẹ ọmọ ijọ Kristi, iwọ di ẹya ara Rẹ; bi iwọ ba di ara Rẹ, nitori naa iwọ kun fun ẹda ọrun. . . . Ah, bi awọn eniyan ba le ni oye anfani yii, igbesi aye wọn yoo ti jẹ mimọ, alailabawọn, ati alailẹṣẹ tó, bawo ni gbogbo ogo aye yii yoo ti jẹ ẹlẹgbin to nigba ti a ba fi we ogo inu wọn,—ogo naa ti oju ẹran ara ko le ri.”

Awọn kan wa lara awọn akẹkọ Lefevre ti wọn n fi tọkantọkan tẹti si ọrọ rẹ, wọn yoo tẹsiwaju lati maa kede otitọ leyin ọpọ ọdun ti ohùn olukọ naa ba dakẹ. Iru wọn ni William Farel. Ọmọ awọn obi onifọkansin, ti a kọ lati gba awọn ikọni ijọ pẹlu igbagbọ bi ọmọde, o le sọ gẹgẹ bi Pọlu ti sọ nipa ara rẹ wipe: “Gẹgẹ bi ẹya isin wa ti o le julọ ti n ṣe Farisi ni emi.” Iṣe 26:5. O ṣe ẹsin Romu tọkantọkan, o si kun fun itara lati pa gbogbo awọn ti wọn ba gboya lati tako ijọ run. O sọ ni ọjọ iwaju nigba ti o n sọ nipa abala yii ninu igbesi aye rẹ

wipe, “Maa pa eyín mi keke bi ìkooko ti o n binu nigba ti mo ba gbọ ti ẹnikan ba sọrọ tako popu.” Ko kaarẹ ninu bi o ti n jọsin awọn eniyan mimọ, pẹlu Lefevre, wọn a maa yi awọn ile ijọsin ti wọn wa ni Paris kiri, wọn a maa jọsin lori pẹpẹ, wọn a si maa fi ẹbun ṣe awọn ojubọ mimọ lọṣọ. Ṣugbọn awọn iṣẹ wọnyi ko le mu alaafia ọkan wa. Idalẹbi ẹṣẹ ko fi i silẹ, gbogbo iṣẹ idariji ti o ṣe ko le mu u kuro. Bi ohùn ti o wa lati ọrun, o tẹti silẹ si ọrọ Alatunṣe naa: “Nipasẹ oore ọfẹ ni igbala.” “A da alailẹṣẹ lẹbi, a si tu ọdaran silẹ.” “Agbelebu Kristi nikan ṣoṣo ni o ṣi ilẹkun ọrun, ti o si ti ilẹkun ipo oku.

Farel fi tayọtayọ gba otitọ naa. Pẹlu iyipada ọkan ti o dabi ti Pọlu, o yiju kuro ninu igbekun aṣa wa si ominira awọn ọmọ Ọlọrun. “Dipo ọkan apaniyan bii ti ikooko ti n ṣiwere,” o pada wa sọ pe, “bi ọdọ aguntan ọlọkan tutu ti ko le ṣeni nijamba, o gba ọkan rẹ kuro lọdọ popu patapata, o si fifun Kristi.”

Bi Lefevre ti n tẹsiwaju lati tan imọlẹ naa laarin awọn akẹkọ rẹ, Farel, onitara ninu iṣẹ Kristi gẹgẹ bi o ti ṣe ninu iṣẹ popu, jade lati kede iṣẹ naa ni gbangba. Oloye ijọ kan, bisobu ti Meaux, darapọ mọ wọn laipẹ. Awọn olukọ miran ti wọn ti goke agba nitori ẹbun ati ẹkọ wọn darapọ mọ wọn lati kede iyinrere, o si ni awọn atẹle laarin gbogbo eniyan, lati ile awọn onisẹ ọwọ ati aroko titi de aafin ọba. Arabinrin ọba Francis I, ọba ti o jẹ ni igba naa gba igbagbọ ti a fọ mọ yii. Ọba funra rẹ, ati iya iyawo ọba fi oju rere wo o fun igba diẹ, pẹlu ireti nla awọn Alatunṣe n wo igba ti a yoo jeere France wa si inu iyinrere.

Ṣugbọn ireti wọn ko ni wa si imuṣẹ. Ijiya ati inunibini ni o n duro de awọn ọmọleyin Kristi. Ṣugbọn pẹlu aanu, a bo eyi kuro ni oju wọn. Akoko alaafia wa ki wọn baa le ri okun lati pade wahala; iṣẹ Atunṣe si n gbilẹ ni kiakia. Bisọbu ti Meaux ṣiṣẹ takuntakun lati kọ awọn eniyan ati awọn alufa ni agbegbe rẹ. O mu awọn alufa alaimọkan ati oniwa ibajẹ kuro, bi o ba si ti ṣe ṣe e ṣe to a fi awọn ti wọn mọwe, ati olufọkansin ropo. Bisọbu naa fẹ ki awọn eniyan naa o ni ọrọ Ọlọrun funra wọn, o si ṣe eyi kankan. Lefevre ṣe itumọ Majẹmu Tuntun; ni akoko naa gan an ti Bibeli Luther ni ede Germany n jade kuro ninu ile itẹwe ni Wittenberg, a n tẹ Majẹmu Tuntun ni ede French jade ni Meaux. Bisọbu naa ṣe ohun gbogbo ti o yẹ ti o tun na owo lati ri wipe o wa kaakiri agbegbe rẹ, laipẹ, awọn agbẹ ni Meaux ni Iwe Mimọ.

Bi arinrin ajo ti n ṣegbe lọ nitori ongbẹ ti n fi ayọ wo orisun omi, bẹẹ gẹgẹ ni awọn ọkan wọnyi ṣe gba iṣẹ iranṣẹ lati ọrun. Awọn oṣiṣẹ ninu oko, awọn onisẹ ọwọ ni ibi iṣẹ wọn, n fi ayọ kun iṣẹ ojumọ wọn nipa sisọ nipa awọn otitọ ti wọn ṣe iyebiye to wa ninu Bibeli. Ni aṣalẹ, dipo ki wọn lọ si ile ọti, wọn a pejọ pọ sinu ile ara wọn lati ka ọrọ

Ọlọrun, wọn a si jumọ parapọ ninu adura ati iyin. Iyatọ nla fi ara han ninu awọn ileto wọnyi. Bi o tilẹ jẹ wipe wọn jẹ otoṣi, awọn ti ko kẹkọ, ti wọn jẹ agbẹ, agbara oore ọfẹ Ọlọrun ti n yini pada, ti si n gbeni soke fi ara han ninu aye wọn. Onirẹlẹ, onifẹ, ati oniwa mimọ, wọn duro gẹgẹ bi ẹlẹri si ohun ti iyinrere le ṣe fun awọn ti wọn ba fi tọkantọkan gba a.

Itansan ina ti a tan ni Meaux rin jinna gan an ni. Ojoojumọ ni iye awọn ti wọn n yipada n pọ si. Ibinu awọn alaṣẹ ijọ ko fi ara han fun igba diẹ nitori pe ọba kẹgan aimọkan awọn ajẹjẹ ẹsin; ṣugbọn nikẹyin awọn adari ijọ padi ri ohun ti wọn n fẹ. A gbe igi isuninina ro. A fi ipa mu bisọbu ti Meaux lati yan ninu ina tabi ki o yi ohun rẹ pada, o yan eyi ti o rọrun ju; ṣugbọn pẹlu isubu adari yii, awọn agbo rẹ si duro ṣinṣin. Ọpọlọpọ ni wọn jẹri fun otitọ ninu ina. Pẹlu igboya ati iduroṣinṣin wọn ninu ina, awọn Kristẹni onirẹlẹ wọnyi ba ọpọ awọn ti koi tii gbọ ijẹri wọn ri ni akoko alaafia sọrọ.

Ki i ṣe awọn alaini ati awọn otoṣi nikan ni wọn gboya lati jẹri fun Kristi laarin ijiya ati ẹgan. Ninu gbọngan ile iṣọ ati ni aafin, a ri awọn ọkan pataki ti otitọ ṣe iyebiye loju wọn ju ọrọ, ipo, ani ati ẹmi funra rẹ lọ. Ihamọra ọba fi ẹmi giga ati ẹmi iduroṣinṣin han ju aṣọ ati fila bisọbu lọ. Louis ti Berquin ti ile ti o dara jade wa. O jẹ jagunjagun onigboya o tun mọ iwaawu ni aafin, o fi ara rẹ jin fun ẹkọ, o ni iṣesi ti o wuni, iwa rẹ si jẹ alailabawọn. Onkọwe kan sọ wipe, "O fi tọkantọkan tẹle ofin ijọ padi, o si nifẹ lati gbọ mass ati iwaasu; . . . o de iwa rẹ lade nipa kikorira ẹsin Luther pẹlu ikorira ti o yatọ." Ṣugbọn bii ti ọpọ awọn eniyan yoku, Ọlọrun dari rẹ si Bibeli, o si ya a lẹnu wipe "ki i ṣe ikọni Romu, ṣugbọn titi ti Luther" ni o wa nibẹ. Lati akoko naa lọ, o fi ara rẹ jin fun iṣẹ iyinrere.

"Ẹni ti o mọwe julọ ninu gbogbo awọn ijoye France," ijafafa ati isọrọjageere rẹ, igboya ti kii baku ati itara akikanju rẹ, ati agbara rẹ ninu aafin,—nitori pe ọba fẹran rẹ,— jẹ ki gbogbo eniyan o ri gẹgẹ bi ẹni ti a yan lati jẹ Alatunṣe fun orilẹ ede rẹ. Beza sọ wipe: "Berquin i ba jẹ Luther keji, bi o ba ṣe wipe o ri afọbajẹ keji ninu Francis I." Awọn ẹlẹsin padi n kigbe wipe, "O buru ju Luther lọ." Awọn ẹlẹsin Romu ni France bẹru rẹ ju u lọ ni tootọ. Wọn sọ ọ sinu ọgba ẹwọn gẹgẹ bi ẹlẹkọ odi, ṣugbọn ọba tu u silẹ. Fun ọpọ ọdun, ijakadi naa n tẹsiwaju. Francis n ṣiyemeji laarin Romu ati iṣẹ Atunṣe, o si n fi ara da itara gbigbona awọn ajẹjẹ ẹsin ni igba miran, a tun da wọn lẹkun ni igba miran. Ẹẹmẹta ni awọn alaṣẹ ijọ padi ju Berquin sinu ọgba ẹwọn, ṣugbọn ọba n tu silẹ, nitori ti o fẹran ijafafa ati iwa rere rẹ, o kọ lati fi silẹ fun arankan awọn oloye ijọ.

A ki Berquin nilọ nipa iru ewu ti o le wu u ni France, a si rọ ọ lati tẹle iṣiṣẹ awọn ti wọn wa aabo nipa mimọọmọ kuro ni ile. Erasmus ti

i ṣe ojo ati arirebaniję, pẹlu ọla ikẹkọ rẹ, o baku ninu iwa akikanju o kọ lati ri ẹmi ati ipo bi ohun ti o kere si otitọ, o kọwe si Berquin wipe: “Beere ki a ran ọ gẹgẹ bi aṣoju ọba lọ si orilẹ ede miran; rin irin ajo lọ si Germany. O mọ Beda ati iru awọn eniyan bii tirẹ — o jẹ ẹranko buburu olori popu ti n yọ oró ni gbogbo ara. Legioni ni orukọ awọn ọta rẹ n jẹ. Bi igbagbọ rẹ ba ju ti Jesu Kristi lọ, wọn ko ni jẹ ki o lọ titi ti wọn yoo fi pa ọ ni ipa ailaanu. Maṣe ni igbẹkẹle pupọ ninu aabo ọba. Ninu ohun gbogbo, maṣe gba mi niyanju pẹlu ikọni nipa ọrọ Ọlọrun.”

Ṣugbọn bi ewu ti n pọ si, bẹẹ ni itara Berquin naa n lokun si. Dipo ki o gba imọran ati ọgbọn arirebaniję ti Erasmus, o pinu lati ṣe awọn ohun ti o gboya si ni. Kii ṣe wipe a gbeja otitọ nikan, ṣugbọn yoo tun ṣe atako èke. Ẹsun ẹkọ odi ti awọn ẹlẹsin Romu fi kan an ni o yi le wọn lori pada. Awọn ti wọn ṣe akitiyan ti wọn si korò julọ ninu awọn ọta rẹ ni awọn ọmọwe ati awọn ajẹjẹ ẹsin ti ẹka ti n kọ nipa Ọlọrun ninu ile ẹkọ giga nla ti Paris, ọkan ninu aṣẹ ti o ga julọ ninu ilu ati orilẹ ede naa. Lati inu iwe awọn ọmọwe wọnyi, Berquin yọ awọn koko ọrọ mejila eyi ti o kede ni gbangba pe wọn “tako Bibeli, ti wọn si jẹ ẹkọ odi;” o si parọwa si ọba lati jẹ onidajọ lori ariyanjiyan naa.

Ọba yara kankan fi agbara ati ijafafa awọn ẹgbẹ mejeeji yii we ara wọn, ti inu rẹ si dun wipe oun ni anfani lati sẹ igberaga awọn alufa ọlọkan giga wọnyi rọ, o sọ fun awọn ẹlẹsin Romu lati fi Bibeli gbeja ara wọn. Wọn mọ daradara wipe ohun ija yii ko le ran wọn lọwọ pupọ; itimọle, ifiyajẹni, ati isuninina ni ohun ija ti wọn le lo daradara. Bayi ni iṣẹlẹ ṣe yipada ti awọn funra wọn ri wipe wọn ti fẹ ṣubu sinu koto ti wọn fẹ ju Berquin si. Pẹlu iyalẹnu, wọn wa ọna abayọ fun ara wọn.

“Ni akoko naa gan ni a ba ère Wundia ti o wa ni ẹba adugbo kan jé.” Irọkẹkẹ nla bẹ silẹ ninu ilu. Ọpọ awọn eniyan ni wọn lọ sibẹ lati ṣọfọ ti wọn si binu. Eyi mu ọba lọkan pupọpupọ. Eyi si jẹ anfani ti awọn ajẹjẹ ẹsin le lo daradara, wọn si yara kankan lati lo o. Wọn kigbe wipe, “Ayọrisi awọn ikọni Berquin niyii.” “Iṣọtẹ awọn atẹle Luther yii yoo fẹrẹ doju ohun gbogbo bolẹ—ẹsin, ofin, ani itẹ funra rẹ.”

A tun mu Berquin lẹẹkan si. Ọba kuro ni Paris, bayi ni a ṣe fi awọn ajẹjẹ ẹsin silẹ lati ṣe ifẹ inu wọn. A ṣe igbẹjọ Alatunṣe naa a si da ẹjọ iku fun; ki Francis ma baa tun wa gba a silẹ, a mu idajọ naa ṣẹ ni ọjọ naa gan an ti a ṣe. A mu Berquin lọ si ibi ti wọn a ti pa ni ọsan. Ọpọ eniyan ni wọn pejọ lati wo iṣẹlẹ naa, wọn n woye pẹlu iyalẹnu ati iyemeji wipe a mu ẹlẹṣẹ naa lati inu awọn ti wọn dara julọ ti wọn si gboya julọ lati inu awọn ile oloye ni France. Iyalẹnu, ibinu, ẹgan, ati ikorira kikoro kun oju awọn ero ti wọn pejọ naa; ṣugbọn ibanujẹ ko si ni oju ẹnikan nibẹ. Ero ajẹriku naa jinna rere kọja iṣẹlẹ idarudapọ ibẹ yẹn; ohun ti o mọ ni wipe Oluwa wa pẹlu oun.

Ẹranko didọti tí o gùn, ibojuję awọn oninunibini rẹ, iku ẹlẹru ti yoo ku—ko kọbi ara si awọn wọnyi; Ẹni ti o wa laaye, ti O ku, ti O si tun wa laaye titi lae, ti O si ni kọkọrọ ipo oku wa lęgbę rẹ. Oju Berquin tan pẹlu imọlẹ ati alaafia ọrun. O wọ aṣọ daradara, o wọ "aṣọ àrán, aṣọ ìlekè satin ati ṣéda alarabara, ati ṣokoto oniwura." O fẹ jẹri si igbagbọ rẹ niwaju Ọba awọn ọba ati gbogbo agbala aye ti n woran, ko si si ibanuję naa bi o tile kere to ti yoo ba ayọ rẹ jẹ.

Bi iwọde naa ti n lọ diędiẹ laarin awọn adugbo ti wọn kun fun ero, awọn eniyan ṣe akiyesi pẹlu iyalẹnu, alaafia ti o han kedere, ati ayọ iṣęgun ti o han ni oju ati irisi rẹ. Wọn sọ wipe, "O dabi ẹniti o joko ninu tęmpili, ti o n ṣe aṣaro lori awọn ohun mimọ."

Ni ibi idanasunni, Berquin gbiyanju lati ba awọn eniyan sọrọ diẹ; ṣugbọn awọn alufa ajęję ęsin bęru ohun ti o le yọri si, wọn bęrę si ni pariwo, ti awọn jagunjagun si n lu ohun ija wọn papọ mọ ara wọn, ariwo naa bo ohùn ajẹriku naa mọlẹ. Bayi ni awọn ọlaju ati alaṣẹ ijọ ni ilu ọlaju Paris ni 1529 ṣe "ṣe apęęrę ti ko boju mu lati maa bo ọrọ pataki ẹni ti n ku lọ mọlẹ ni ibi iṣekupani fun awọn eniyan ni ọdun 1793."

A yi Berquin lọrun, a si dana sun un. Iroyin iku rẹ ko ibanuję ba awọn ọrẹ iṣẹ Atunṣe kaakiri ilẹ France. Ṣugbọn apęęrę rẹ ko parẹ. Awọn ẹlẹri fun otitọ sọ wipe, "Awa naa ṣetan lati fi ayọ koju iku, nipa gbigbe oju wa si igbesi aye ti n bọ."

Ni akoko inunibini ni Meaux, a ko fun awọn olukọ igbagbọ ti a tunṣe ni anfani lati waasu, wọn si lọ si awọn ibomiran. Lęyin igba diẹ, Lefevre lọ si Germany. Farel pada si ilẹ abinibi rẹ ni iha ila oorun France lati lọ tan ina imọlẹ kaakiri ni ilu ti o gbe dagba. Wọn ti gbọ iroyin ohun ti o n ṣẹlẹ ni Meaux, awọn eniyan si tęti silẹ si otitọ ti o fi n kọni pẹlu itara ati igboya. Laipę awọn alaṣẹ ilu taji lati pa lęnu mọ, a si le kuro ninu ilu naa. Bi o tilẹ jẹ wipe ko le ṣiṣẹ ni ita gbangba mọ, o lọ si awọn abule ati ileto, o si n kọ awọn eniyan ninu ile wọn ati ninu igbo; o n gbe ninu igbo ati laarin iho okuta, nibi ti o saba maa n lọ ni igba ewe rẹ. Ọlọrun n pese rẹ silẹ fun awọn idanwo ti o tobi si ni. O sọ wipe, "Agbelebu, inunibini, ati ete Satani, ti a ti ki mi nilọ nipa wọn ṣaaju ko baku, wọn tilẹ nira ju eyi ti mo le fi ara da lọ; ṣugbọn Ọlọrun ni Baba mi; O n fun mi, yoo si maa fun mi ni okun ti mo nilo."

Gęgę bi o ti ṣẹlẹ ni igba awọn apostoli, inunibini "wa yọri si ilọsiwaju iyinrere." Filipi 1:12. A le wọn kuro ni Paris ati Meaux, "awọn ti a fọnka naa si lọ si ibi gbogbo, wọn n waasu ọrọ naa." Iṣe 8:4. Bayi ni imọlẹ naa ṣe ri ọna wọ ọpọlọpọ agbegbe ti wọn jijina rere ni ilẹ France.

Ọlọrun si n pese awọn oṣiṣẹ lati mu ki iṣẹ rẹ o lọsiwaju. Ninu ọkan lara awọn ile ękọ ti wọn wa ni Paris ni ọdọ ti o nironu, ti o si ni ẹmi idakẹję kan wa, o n ṣe afihan iye ti o yè kooro, o si le ronu jinlẹ, a

mọ ọ fun iwa ailẹgan, ọpọlọ ti o ja fafa, ati ifọkansin ẹsin rẹ. Ijafafa ati iwuwasi rẹ so ọ di ohun amuyangan fun ile ẹkọ rẹ laipẹ, a si n fi idaniloju n nireti wipe John Calvin yoo jẹ ọkan ninu awọn olugbeja ijọ ti o jafafa, ti o si lọla julọ. Ṣugbọn itansan imọlẹ ọrun tan si Calvin, ani laarin ogiri ẹkọ eniyan ati igbagbọ asan ti o wa. O gbọ nipa awọn ikọni tuntun naa pelu iwariri, o si gbagbọ wipe awọn elekọ odi ye fun ina ti a fi n sun wọn. Sibẹ laimọ, o fi oju koju pẹlu ẹkọ odi, o wa di dandan fun lati dan agbara ikọni Romu wo nipa fifi ba ikọni Protestant ja.

Ibatan Calvin kan, ẹni ti o ti darapọ mọ awọn Alatunṣe, wa ni Paris. Awọn ibatan mejeeji yii saba maa n pade, wọn si maa n jiroro lori awọn ohun ti wọn n damu ẹsin Kristẹni. Olivean ti i ṣe Protestant sọ wipe, "Orişi ẹsin meji pere ni o wa laye." Abala ẹsin kan ni eyi ti awọn eniyan gbe kalẹ, ninu eyi ti eniyan n gba ara rẹ la nipa iṣẹ isin ati iṣẹ rere; ekeji ni ẹsin kan ṣoṣo ti a fihan ninu Bibeli, eyi ti o n kọ eniyan lati maa wọna fun igbala lati ọdọ oore ọfẹ Ọlọrun nikan ṣoṣo."

Calvin sọ wipe, "Mi o ni ohunkohun ṣe pẹlu ikọni tuntun rẹ; ṣe o ro wipe mo ti wa ninu aṣiṣe ninu gbogbo ọjọ aye mi ni?"

Ṣugbọn ero kan dide ninu ọkan rẹ, eyi ti ko le mu kuro pẹlu agbara rẹ. O ronu lori ọrọ ibatan rẹ yii ni ohun nikan ninu yara rẹ. O ni imọlara idalẹbi ẹṣẹ; o ri ara rẹ niwaju Adajọ mimọ ati olododo laini olubalaja. Ibalaja awọn eniyan mimọ, awọn iṣẹ rere, awọn isin ijọ, gbogbo wọn ko lagbara lati mu ẹṣẹ kuro. Ko ri ohunkohun niwaju rẹ ayafi okunkun ainireti ayeraye. Lasan ni awọn ọmọwe ijọ ṣe akitiyan lati tán isoro rẹ. Ijẹwọ ẹṣẹ, iṣẹ ironupiwada ti o ṣe ko mu ere kankan wa. Wọn ko le ba ọkan laja pẹlu Ọlọrun.

Nigba ti o si n ṣe iṣẹ ainitumọ rẹ yii, Calvin ni anfani ni ọjọ kan lati ṣe abẹwo si ibi ojutaye kan, o ri bi wọn ti n dana sun ẹlẹkọ odi kan. Ẹnu ya a nigba ti o ri alaafia ti o fi ara han ni oju ajẹriku naa. Laarin ijiya iku oró, ati labẹ idalẹbi inira ijọ, o fi igbagbọ ati igboya han, eyi ti akẹkọ ti o jẹ ọdọ yii fi we okunkun ati ainireti ara rẹ, nigba ti o n gbe ni igbọran ti o nira julọ si ofin ijọ. O mọ wipe lori Bibeli ni awọn ẹlẹkọ odi gbe igbagbọ wọn le. O pinu lati kẹkọ rẹ, ki o si ṣe awari, bi o ba ṣe e ṣe, aṣiri ayọ wọn.

Ninu Bibeli, o ri Kristi. O kigbe wipe, "Baba irubọ Rẹ ti tu ibinu Rẹ loju; ẹjẹ Rẹ ti fọ abawọn mi danu; agbelebu Rẹ ti ru egun mi; iku Rẹ ti ṣe imukuro ẹṣẹ mi. A ti wa ọpọlọpọ iwa omugọ ti ko ni itumọ fun ara wa, ṣugbọn Iwọ gbe ọrọ Rẹ siwaju mi bi imọlẹ, Iwọ si fi ọwọ bami ni ọkan, ki n le korira gbogbo iṣẹ miran ayafi ti Kristi nikan ṣoṣo."

Calvin kẹkọ lati di alufa. Nigba ti o jẹ ọmọ ọdun mejila pere, a yan an lati jẹ oniwaasu ni ile ijọsin kekere kan, ti bişọbu si ti fa ori rẹ ni ibamu pẹlu ofin ijọ. Ko gba iyasimimọ, bẹẹ ni ko ṣe ojuṣe ti o yẹ fun

awọn alufa, sibẹ o di ọkan ninu awọn ẹgbẹ alufa, o ni orukọ ti o rọ mọ ipo yii, o si n gba owo ti o tọ nitori rẹ.

Ni akoko yii, nigba ti o ro wipe oun ko le di alufa, o lọ kọ nipa ofin, ṣugbọn lẹyin-ọrẹyin, o fi eyi silẹ, o wa lọ fi ẹmi rẹ jin fun iyinrere. Ṣugbọn o lọra lati di olukọ ni gbangba. O maa n tiju, ojuṣe ipo naa si di ẹru wuwo ru u, o wa pinu lati si maa kẹkọ na. Nikẹyin, o gba ipẹ awọn ọrẹ rẹ. O sọ wipe, "O jẹ ohun iyanu ki ẹni ti ko lokiki o de iru ipo nla yii."

Laisi ariwo, Calvin bẹrẹ iṣẹ rẹ, awọn ọrọ rẹ si dabi iri ti n tu ilẹ lara. O ti kuro ni Paris, o wa ni ileto kan ti o wa labẹ aabo ọmọ ọbabinrin Margaret, ẹni ti o fẹran iyinrere, ti o si daabo bo awọn atẹle rẹ. Calvin si jẹ ọdọ, oniwapẹlẹ ti ko lágbaja. O bẹrẹ iṣẹ rẹ pẹlu awọn eniyan ninu ile wọn. Awọn ara ile a yii ka, yoo ka Bibeli, yoo si sọ awọn otitọ igbala. Awọn ti wọn gbọ iṣẹ iranṣẹ naa sọ iyinrere naa fun awọn miran, laipẹ olukọ naa kuro ninu awọn ilu lọ si awọn ileto ati abule ti wọn wa ni ayika. Ati ile iṣọ, ati ahéré ni o wọ, o si tẹsiwaju lati fi ipilẹ awọn ijọ ti yoo ni awọn ajẹri onigboya fun otitọ lelẹ.

Lẹyin oṣu diẹ, o pada si Paris. Ariyanjiyan ti o yatọ bẹ silẹ laarin agbo awọn ọmọwe ati olukọ. Ẹkọ ede atijọ dari awọn eniyan si Bibeli, ti ọpọlọpọ ti ko mọ itumọ otitọ rẹ si n fi gbogbo agbara ṣe alaye rẹ, ani ti wọn tun n ba awọn akikanju ninu ẹsin Romu ṣe ariyanjiyan. Bi o tilẹ jẹ wipe Calvin jẹ alariyanjiyan ti o kunju oṣuwọn ninu ẹkọ nipa Ọlọrun, o ni iṣẹ lati ṣe, eyi ti o ga ju ti awọn akẹkọ alariwo yii lọ. A ti ta awọn eniyan lọpọlọ ji, akoko si ti to lati ṣe alaye otitọ fun wọn. Nigba ti ariyanjiyan nipa ẹkọ nipa Ọlọrun n gba gbọngan awọn ile ẹkọ giga kan, Calvin n lọ lati ile de ile, o n ṣi Bibeli fun awọn eniyan, o si n sọ fun wọn nipa Kristi, ati Ẹni ti a kan mọ agbelebu.

Ninu iṣeto Ọlọrun, Paris yoo tun gba ipẹ miran lati gba iyinrere. A ti kọ ipẹ Lefevre ati ti Farel silẹ, ṣugbọn gbogbo awọn eniyan inu ilu nla naa yoo tun gbọ iṣẹ iranṣẹ naa lẹẹkan si. Nitori ọrọ oṣelu, ọba koi tii ṣe ipinu lati kin Romu lẹyin ni atako si iṣẹ Atunṣe. Margaret si ni ireti wipe ẹsin Protestant yoo ṣẹgun ni France. O pinu wipe a nilati waasu igbagbọ ti a fọmọ yii ni Paris. Nigba ti ọba ko si nile, o paṣẹ ki awọn oniwaasu Protestant o waasu ninu awọn ile ijọsin ti wọn wa ninu ilu naa. Nitori ti awọn oloye ijọ padi ko faaye gba eyi, ọmọ ọba naa wa ṣi aafin silẹ. A sọ gbọngan kan di ile ijọsin, a si ṣe ikede wipe lojoojumọ, laarin akoko ti a yan, a yoo maa waasu, gbogbo eniyan ni a pe laika ipo wọn si. Ọpọ eniyan ni wọn wọ ọ si ibi isin naa. Ki i ṣe ile ijọsin naa nikan, ṣugbọn ati awọn gbọngan ti wọn doju kọ ọ ni wọn kun fọfọ. Ọgọọrọ awọn eniyan ni wọn n pejọ lojoojumọ—awọn ijoye, oloṣelu, amofin, onisowo, ati awọn onisẹ ọwọ. Dipo ki ọba o dawọ

apejọ yii duro, o paṣe ki a ṣi ile ijọsin meji silẹ ni Paris. Ọrọ Ọlọrun koi tii mi ilu naa bayẹn ri. Ẹmi iye lati ọrun wa mi si awọn eniyan. Iwọntuwọnsi, iwa mimọ, ibọwọfun ofin, ati imura siṣẹ n gba ipo iwa ọmuti, ailekora-ẹni-nijanu, ija ati ọlẹ.

Ṣugbọn awọn oloye ijọ ko kawọ gbinra. Sibẹ ọba ko jẹ ki a da iwaasu naa duro, wọn wa yiju si awọn eniyan. Ko si ohun ti wọn ko ṣe tan lati ru ibẹru, aimọkan, ati igbonara awọn eniyan alaimọkan ati ti wọn gba erokero gbọ soke. Ni gbigba awọn olukọ eke rẹ gbọ laironu, Paris, bi i Jerusalemu ko mọ igba ibẹwo rẹ, tabi awọn ohun ti wọn ni i ṣe pẹlu alaafia rẹ. Fun ọdun meji, a waasu ọrọ Ọlọrun ninu olú ilu naa; ṣugbọn nigba ti ọpọ awọn eniyan gba iyinrere, eyi ti o pọju ninu awọn eniyan ni wọn kọ ọ silẹ. Francis fi ara han gẹgẹ bi onifarada lati mu ero rẹ ṣẹ ni, awọn atẹle popu n ni agbara si. Lẹẹkan si, a ti ilẹkun awọn ile ijọsin, a tun gbe igi idanasunni ro.

Calvin si wa ni Paris, o n kẹkọ, o n ṣe aṣaro, o si n gba adura lati pese ara rẹ silẹ fun iṣẹ ọjọ iwaju rẹ, bẹẹ ni o si n tan imọlẹ naa ka. Nikẹyin, ara bere si ni fu u. Awọn alaṣẹ pinu lati sun un nina. O ro wipe oun ni aabo ninu ibi ti o sapamọ si, ko ro nipa ewu, nigba ti awọn ọrẹ rẹ yára wa sinu yàrá rẹ pẹlu iroyin wipe awọn iranṣẹ ilu n bọ lati fipa mu. Ni akoko naa ni a gbọ ti wọn n kan ilẹkun ita. Ko si akoko lati fi ṣofo. Diẹ lara awọn ọrẹ rẹ da awọn alaṣẹ duro lẹnu ọna, nigba ti a gbe Alatunṣe naa sokalẹ lati oju ferese, o si yara salọ si igun ilu naa. O ri aabo ni ile oṣiṣẹ kan ti i ṣe ọrẹ iṣẹ atunṣe, o fi ara rẹ pamọ ninu aṣọ ẹni ti o gba a sile, o gbe ọkọ si ejika, o si bẹrẹ irin ajo rẹ. O lọ si iha guṣu, o tun ri aabo ninu ijọba Margaret lẹẹkan si.

O duro fun oṣu diẹ nibi, o wa lailewu labẹ aabo awọn ọrẹ rẹ ti wọn jẹ alagbara, o tun bẹrẹ si ni i kọ ẹkọ rẹ bi i ti iṣaaju. Ṣugbọn ọkan rẹ fẹ lati jere ọkan France, ko si fẹ wa laiṣiṣẹ fun igba pipẹ. Ni kete ti iji naa dawo duro diẹ, o wa ibi iṣẹ tuntun miran si Poitiers, ti ile ẹkọ giga kan wa, ti wọn ti fi oju rere wo igbagbọ tuntun yii. Awọn eniyan lati ibi gbogbo fi ayọ tẹti si iyinrere. Ko si iwaasu ita gbangba, ṣugbọn ninu ile alaṣẹ agba ilu naa, ninu ile ara rẹ, ati nigba miran ninu ọgba ilu, Calvin a waasu ọrọ iye ainipẹkun fun awọn ti wọn ba fẹ lati gbọ. Lẹyin igba diẹ, bi iye wọn ti n pọ si, wọn ri wipe ko si ewu bi wọn ba pejọ pọ si òde ilu naa. Iho ilẹ kan wa ni ẹba ibi tooro, ti o jinlẹ kan, nibi ti igi ati awọn apata ti wọn wa ni oke rẹ jẹ ki o fi ara sin daradara, ibẹ ni a yan fun ibi ipade. Awọn ẹgbẹ kekeeke n gba orisirisi ọna kuro ni ilu lati debẹ. A ka Bibeli soke, a tun ṣe alaye rẹ ninu ibi ti o fara sin yii. Awọn Protestant ni France jẹ onjẹ alẹ Oluwa fun igba akọkọ nibẹ. Lati inu ijọ kekere yii a ran awọn ajiyinrere olufọkansin diẹ jade.

Calvin tun pada si Paris lẹẹkan si. Koi tii sọ ireti nu wipe France gẹgẹ bi orilẹ ede yoo tẹwọ gba iṣẹ Atunṣe. Ṣugbọn o ri wipe ko si aye lati ṣiṣẹ rara, lati kọni ni iyinrere jẹ ọna taara lọ si ibi isunni nina, nikẹyin, o pinu lati lọ si Germany. Ko pẹ ti o kuro ni France ti iji kan bọ lu awọn Protestant, eyi ti o jẹ wipe, bi o ba si wa nibẹ ni, i ba bá iparun naa lọ.

Awọn Alatunṣe France, ninu itara wọn lati ri ki orilẹ ede wọn o wa nibi kan naa pẹlu Germany ati Switzerland, wọn pinu lati ṣe atako si awọn ẹkọ eke Romu, eyi ti yoo ta gbogbo orilẹ ede naa ji. Nitori naa, a lẹ iwe ti o ṣe atako mass mọ gbogbo France ni ọjọ kan. Dipo ki o jẹ ki iṣẹ atunṣe o tẹsiwaju, awọn ẹgbẹ onitara ti ko mọ eto yii, mu iparun wa, ki i ṣe si ori awọn ti n waasu rẹ nikan, ṣugbọn si ori awọn ọrẹ igbagbọ ti a fọ mọ ni gbogbo ilẹ France. O fun awọn ẹlẹsin Romu ni ohun ti wọn ti n wa fun igba pipẹ—ohun ti yoo mu ki wọn beere fun iparun awọn ẹlẹkọ odi patapata gẹgẹ bi oniwahala ti o lewu si alaafia itẹ ati ti ilu.

Nipasẹ awọn ti a ko mọ kan—boya ọrẹ ti ko mọ ohun ti o yẹ ni, tabi, ọta alarekereke, a ko mọ—a lẹ ọkan lara awọn iwe pelebe yii mọ ilẹkun yara ọba. Ikorira ọba ru soke. A ṣe atako igbagbọ eke ijọ ti a ti n bọwọ fun fun ọjọ pipẹ wá lailaanu ninu iwe yii. Igboya ti ko ṣe e tẹle ti o mu iru awọn otitọ ti wọn janilaya wọnyi wa siwaju ọba bi ọba ninu gidigidi. O duro pẹlu iyalẹnu fun igba diẹ, o n wariri laile sọrọ. O wa sọrọ pẹlu ibinu wipe: “Ẹ mu gbogbo ẹni ti ẹ ba funra si wipe o jẹ atẹle Luther. Maa pa gbogbo wọn run laiku ẹyọ kan.” A ti ṣe ipinu ná. Ọba ti pinu nikẹyin lati duro si ẹgbẹ Romu patapata.

Lọgan ni a bẹrẹ eto fun itimọle gbogbo awọn atẹle Luther ni Paris. Onisẹ ọwọ otoṣi kan, ti o gbagbọ ninu igbagbọ ti a tunṣe ti o saba maa n pe awọn onigbagbọ lọ si ibi kọlọfin wọn ti wọn ti n pejọ pọ, ni a mu, pẹlu ihalẹ wipe yoo ku loju ẹsẹ nibi ti a ti n suni nina, a pasẹ ki o mu awọn aṣoju ijọ padi lọ si ile gbogbo awọn Protestant to wa ninu ilu naa. Inu bi nitori ibeere buburu yii, ṣugbọn nikẹyin ibẹru ina bori rẹ, o si gba lati tu aṣiri awọn arakunrin rẹ. Wọn gbe akara mass siwaju, awọn ẹgbẹ alufa, agbé turari, awọn alufa ajẹjẹ ẹsin, rọgba yii ka, awọn jagunjagun, Morin, awọn ọtẹlẹmuyẹ ọba, pẹlu afinihan naa rọra n lọ laarin ilu naa ni idakẹjẹ. Ohun ti o jọ ni oju awọn eniyan ni wipe wọn n bọwọ fun “akara mimọ” lati le mu iwa ẹgan ti awọn ti n fi ẹhonu han wu si kuro. Ṣugbọn erongba buburu ni wọn fi pamọ si abẹ afihan yii. Bi wọn ba ti de ile atẹle Luther kan, afinihan naa a fun wọn ni ami kan, ṣugbọn ko ni sọrọ. Iwọde naa á duro, wọn a wọ inu ile naa lọ, wọn a wọ awọn idile naa sita wọn a si fi ẹwọn dè wọn, iwọde buburu yii a tun tẹsiwaju lati lọ wa olujiya miran. Wọn “kò dá

ilé kankan si, ẹni nla tabi ẹni kekere, titi de ori awọn olukọ ile ẹkọ giga ti Paris. . . . Morin mi ilu naa tìtì. . . . Akoko ibẹru ni."

A pa awọn olujiya naa pẹlu ijiya buburu, nitori ti a sọ wipe ki ina naa maṣe gbona ju ki irora wọn le pẹ si. Ṣugbọn wọn ku gẹgẹ bi aṣẹgun. Iduroṣinṣin wọn ko yẹ, alaafia wọn ko ṣokunkun. Awọn ti n ṣe inunibini si wọn ko ni agbara lati mi iduroṣinṣin wọn, wọn ri wipe wọn baku. "A pin ohun ifiyajẹni kaakiri gbogbo Paris, ti wọn si n sunni nina lojoojumọ, wọn pa ète yii lati le tan ibẹru ẹkọ odi kálẹ nipa titan ijiya rẹ kalẹ. Ṣugbọn iyinrere ni o ri anfani nikẹyin. Gbogbo ilu Paris ri iru awọn eniyan ti igbagbọ tuntun naa mu sita. Ko si pẹpẹ iwaasu ti o dabi ina ti n sun awọn ajẹriku. Ayọ alaafia awọn eniyan wọnyi fi ara han ni oju wọn bi wọn ti n kọja lọ . . . si ibi ti a yoo ti pa wọn, iwa akikanju wọn bi wọn ti wa laarin ina gbigbona, ki i ṣe igba diẹ ni o yi ibinu pada si ikaanu, ikorira di ifẹ, o si jẹ ẹri ti a ko le ta danu fun iyinrere."

Awọn ti wọn ti pinu lati maṣe jẹ ki ibinu awọn eniyan o sẹrọ, fi awọn orişirişi ẹsun kan awọn Protestant. A fi ẹsun kan wọn wipe wọn n pète lati pa gbogbo ọmọ ijọ Katoliki, lati doju ijọba bolẹ, ati lati pa ọba. Ko si ohunkohun ti wọn le fi fi ìdi awọn ẹsun wọnyi mulẹ. Sibẹ awọn asọtẹlẹ wọnyi yoo wa si imuṣẹ; ṣugbọn labẹ iṣẹlẹ miran, ohun ti yoo fa a yoo si jẹ idakeji si eyi. Awọn iwa ika ti awọn Katoliki n wu si awọn Protestant alaişẹ n ko ara wọn jọ pọ fun igbẹsan, ni ọjọ iwaju yoo si ṣe iparun naa gan an ti wọn sọtẹlẹ si ori ọba, ijọba rẹ, ati si ori awọn ọmọ ijọba rẹ; ṣugbọn awọn alaigbagbọ ati awọn atẹle popu funra wọn ni yoo muṣẹ. Ki i ṣe ifilọlẹ ẹsin Protestant, bikoṣe bi a ti ṣe tẹẹri, ni o fa awọn ijamba nla wa si ori France ni ọgọrun ọdun mẹta lẹyin eyi.

Ifunra si, aifọkantan, ati ibẹru wa gba gbogbo ilu kan. Ninu ibẹru ti o wọpọ yii, a ri bi ikọni Luther ti gbilẹ to laarin awọn ti wọn tayọ ninu ẹkọ, okiki ati iwa rere. Lojiji a dede ri wipe ipo iyi ati ifọkantan ṣofo. Awọn onişẹ ọwọ, awọn tẹwetẹwe, awọn olukọ, awọn ọjọgbọn ninu ile ẹkọ giga, awọn onkọwe, ani ati awọn iranṣẹ ni aafin ọba poora.

Ọpọlọpọ sa kuro ni Paris, wọn sọ ara wọn di isansa kuro ni ilẹ abinibi wọn, ni ọpọ igba, eyi kọkọ fihan wipe wọn fi oju rere wo igbagbọ ti a tunṣe naa. Awọn atẹle popu wo ayika wọn pẹlu iyalẹnu nitori awọn ẹlẹkọ odi ti a ko fiyesi ti wọn fi aaye gba ni aarin wọn. Wọn yi oju ibinu wọn si ori awọn ọpọ eniyan ti wọn jẹ otoşi to wa ni ikawọ wọn ti wọn le fiyajẹ. Awọn ọgba ẹwọn kun, afẹfẹ si dudu nitori eefin ina ti n jo, ti a tan nitori awọn ti wọn jẹwọ iyinrere.

Francis I yin ara rẹ wipe oun jẹ adari ninu ẹgbẹ nla fun işoji ẹkọ, eyi ti o bẹẹrẹ ni ọrundun kẹrindinlogun. Inu rẹ dun lati ko awọn ọmọwe lati gbogbo orilẹ ede jọ si aafin rẹ. Ifẹ rẹ fun ẹkọ ati ikorira rẹ fun aimọkan ati igbagbọ ninu asan awọn ajẹjẹ ẹsin ni o fa a, ni

ọna diẹ, bi a ti fi ara da iṣẹ atunṣe. Ṣugbọn pẹlu itara lati fa ẹkọ odi tu, ẹni ti o fẹran ẹkọ yii pa aṣẹ ti o sọ wipe ki a pa iṣẹ iwe titẹ rẹ kuro ni France! Francis I jẹ ọkan lara ọpọlọpọ awọn apẹẹrẹ ti a kọ silẹ ti o fihan wipe ọlaju iwe ki i ṣe aabo fun ainifarada ẹsin ati inunibini.

Nipa eto itagbangba ti o ṣe pataki kan, France yoo fi ara rẹ jin patapata lati pa ẹsin Protestant run. Awọn alufa beere wipe ki a mu iwa ọyaju ti a wu si Ọrun nipa bibu ẹnu atẹ lu mass kuro nipaṣẹ ẹjẹ, ki ọba si fi ọwọ si iṣẹ laabi yii ni orukọ gbogbo ilu.

January 21, 1535 ni a yan fun ayẹyẹ buburu yii. A ru ibẹru alaimọkan ati ikorira itara alaimoye gbogbo orilẹ ede naa soke. Paris kun fun ọpọlọpọ awọn eniyan ti wọn wa lati gbogbo agbegbe ti wọn yi ka; wọn kun inu awọn adugbo rẹ. Ọjọ naa yoo bẹrẹ pẹlu iwọde nla pataki kan. "A ta aṣọ ọfọ mọ awọn ile ti iwọde naa yoo gba iwaju wọn kọja, ti awọn pẹpẹ si duro lati ibusọ de ibusọ." A tan ina siwaju gbogbo ilẹkun ni ibọwọ fun "ami majẹmu mimọ." Ki oju to mọ, awọn oluwọde ti pejọ si aafin ọba. "Awọn asia ati agbelebu awọn agbegbe rẹ ni wọn kọkọ kọja; lẹyin eyi awọn ara ilu, wọn n rin ni mejimeji, wọn si gbe atupa si ọwọ wọn." Awọn ẹgbẹ ajẹjẹ ẹsin mẹrẹẹrin tẹle, olukuluku wọn ninu aṣọ idanimọ wọn. Lẹyin eyi ni ọpọlọpọ awọn ère ti wọn lokiki. Lẹyin eyi ni awọn ijoye inu ijọ ti wọn wọ aṣọ elese aluko ati aṣọ alawọ pupa ati awọn ohun iṣeraloṣọ, aṣọ daradara ti n dan.

"Bisọbu Paris ni o gbe mass naa labẹ ibori igunwa nla, . . . ti awọn ijoye ẹjẹ mẹrin dìmú. . . . Ọba n rin bọ lẹyin mass naa. . . . Francis I ko de ade, tabi wọ aṣọ igunwa ni ọjọ naa." Pẹlu "ori rẹ ti o ṣi silẹ, oju rẹ ti n wo ilẹ, ati abẹla kan ni ọwọ rẹ," ọba France fi ara han "bi ẹni ti n ṣe ikaanu fun ẹṣẹ." O tẹriba ni irẹlẹ lẹba gbogbo pẹpẹ, ki i ṣe fun awọn iwa ibi ti wọn ko idọti ba ọkan rẹ, tabi fun ẹjẹ awọn alaiṣẹ ti wọn dọti ọwọ rẹ, ṣugbọn fun ẹṣẹ buburu awọn ọmọ ijọba rẹ, ti wọn ni igboya lati ṣe atako mass. Ayaba ati awọn ijoye ilu tẹle, awọn naa n rin ni mejimeji pẹlu atupa lọwọ wọn.

Gẹgẹ bi ara eto ọjọ naa, ọba funra rẹ ni o ba awọn ijoye nla inu ijọba naa sọrọ ninu gbọngan nla ti o wa ni aafin bisọbu. O duro niwaju wọn ni irisi ẹni ti n ṣọfọ, o ṣe idaro "iwa ọdaran, isọrọ odi, ọjọ ibanujẹ ati itiju" ti o wa si ori orilẹ ede wọn ni ọna ti o wọnilọkan. O si pe gbogbo eniyan ilu lati ṣe iranwọ lati pa ẹkọ odi onirira ti o n fi iparun ṣẹruba France run. O sọ wipe, "Bi mo ti jẹ ọba yin ni tootọ, ẹyin arakunrin, bi mo ba ri wipe idibajẹ onirira yii ti ran mọ ọkan ninu awọn ọwọ mi tabi ẹsẹ mi, ma a fifun yin lati ge kuro. . . . Siwaju si, bi mo ba ri ti o sọ ọkan ninu awọn ọmọ mi di aimọ, mi o ni dasí. . . . Emi funra mi ni yoo jọwọ rẹ lọwọ, ti n o si fi rubọ si Ọlọrun." O n sọkun

ninu ọrọ rẹ, gbogbo apejọ naa si sọkun, wọn wi ni ohun kan wipe: “Awa yoo wa laaye, a o si ku fun ẹsin Katoliki.”

Okunkun orilẹ ede ti o kọ imọlẹ otitọ silẹ naa po gan an ni. Oore ọfẹ “ti o mu igbala wa” ti fi ara han; ṣugbọn lẹyin ti France ri agbara ati iwa mimọ rẹ, lẹyin ti onfa ẹwa rẹ ti fa ọpọlọpọ mọra, lẹyin ti itansan rẹ ti mọlẹ si awọn ilu nla ati awọn abule, o yipada, o yan okunkun ju imọlẹ lọ. Wọn kọ ẹbun ọrun silẹ nigba ti a fi fun wọn. Wọn pe ibi ni rere, ati rere ni ibi, titi ti wọn fi ṣubu sinu itan-ara-ẹniije ti wọn mọọmọ yan. Bi o tilẹ je wipe wọn le gbagbọ ni tootọ wipe wọn ṣe Ọlọrun loore ni nipa ṣiṣe inunibini si awọn eniyan Rẹ ni akoko yii, sibẹ iṣẹ atọkanwa wọn ko mu ẹbi wọn kuro. Wọn ti mọọmọ kọ imọlẹ ti i ba gba wọn la kuro ninu ẹtan, kuro ninu didọti ọkan wọn pẹlu ẹbi ẹjẹ, silẹ.

Wọn je ẹjẹ pataki lati fa ẹkọ odi tu ninu katidra nla naa, nibi ti, lẹyin bi ọgọrun mẹta ọdun, orilẹ ede ti o ti gbagbe Ọlọrun alaaye yoo ti gbe Ọlọrunbunrin Imọ si ori itẹ. Wọn tun bẹrẹ iwọde naa, awọn aṣoju France si jade lati bẹrẹ iṣẹ ti wọn jẹjẹ lati ṣe. “A gbe akasọ kalẹ si awọn ibusọ ti ko jinna si ara wọn, nibẹ ni a o ti dana sun awọn Kristẹni Protestant kan laaye, a si ti ṣe eto lati dana si igi naa lara lọgan ti ọba ba ti yọ, ti iwọde naa yoo si duro lati wo ipaniyan naa.” Alaye ijiya ti awọn ajẹri fun Kristi wọnyi la kọja banilọkanjẹ ju eyi ti a le kọ silẹ lọ; ṣugbọn awọn ti n jiya yii ko yẹsẹ. Nigba ti a rọ wọn lati ronupiwada, ọkan dahun wipe: “Ohun ti awọn woli ati awọn apostoli waasu tẹlẹ, ti gbogbo awọn eniyan gbagbọ, nikan ni mo gbagbọ. Igbagbọ mi ni igboya ninu Ọlọrun eyi ti yoo koju ija si gbogbo agbara ipo oku.”

Latigbadegba ni iwọde naa n duro ni ibi ifiyajẹni. Nigba ti wọn de ibi ti wọn ti bẹrẹ ni aafin ọba, awọn ero tuka, ọba ati awọn alufa kuro nibẹ, inu wọn dun si iwọde ọjọ naa wọn si n ki ara wọn ku ori ire wipe iṣẹ ti wọn bẹrẹ yoo tẹsiwaju titi ti yoo fi pa ẹkọ odi run patapata.

A yoo fa iyinrere alaafia ti France kọ silẹ tu patapata lootọ, atubọtan rẹ yoo si buru jọjọ. Ni January 21, 1793, ni ọtadinlaadọta o din meji ọdun, ni ayajọ ọjọ naa gan an ti France fi ara rẹ jin patapata lati ṣe inunibini si awọn Alatunṣe, iwọde miran fun idi ti o yatọ patapata gba aarin awọn adugbo Paris kọja. “Ọba naa ni o tun je ẹni pataki; irọkẹkẹ ati ariwo tun wa; a gbọ igbe lati fi iya je awọn miran si; awọn akasọ ti wọn ti dudu wà pẹlu; awọn iṣẹlẹ ọjọ naa tun pari pẹlu ipaniyan lọna to banilẹru; a wọ Louis XVI, pẹlu bi o ti n jijadu ọwọ rẹ pẹlu awọn oniletubu rẹ ati awọn ti yoo pa, lọ si ibi pepele, nibẹ ni a dè e mọ titi ti aake fi ṣubu le lori, ti ori rẹ si n jo belebele lori pepele.” Kii ṣe ọba nikan ni o jiya; lẹgbẹ ibudo kan naa (ẹgbẹẹdogun din nigba) 2800 eniyan ni wọn padanu ẹmi wọn nibi ibẹnilori ni akoko buburu ti Akoso Ẹru naa.

Iṣẹ Atunṣe fi Bibeli ti a ṣi silẹ fun araye, o n ṣe alaye awọn ilana ofin Ọlọrun, o si n ṣe alaye ohun ti o n fẹ si ọkan awọn eniyan. Ifẹ Ainipẹkun ti ṣipaya ilana ati ẹkọ ọrun fun awọn eniyan. Ọlọrun ti sọ wipe: “Pa wọn mọ ki o si ṣe wọn, nitori eyi ni ọgbọn ati oye rẹ niwaju awọn orilẹ ede ti wọn yoo gbọ awọn ofin wọnyi, ti wọn yoo si wipe, Lootọ orilẹ ede nla yii jẹ ọlọgbọn ati amoye eniyan.” Diuteronomi 4:6. Nigba ti France kọ ẹbun ọrun silẹ, o fun irugbin idarudapọ ati iparun, atubọtan ti a ko le yipada si yori si akoko idoju ijọba bolẹ, ati iṣakoso ẹru.

Ni igba pipẹ ṣaaju ki iwe pelebe to fa inunibini, o ti di dandan ki Farel, ẹni ti o gboya ti o si ni itara o kuro ni ilẹ abinibi rẹ. O lọ si Switzerland, o fi iṣẹ rẹ ti ti Zwingli lẹyin, o ṣeranwọ lati jẹ ki iṣẹ Atunṣe o gbilẹ. Nibi ni o ti lo akoko ti o kẹyin ninu igbesi aye rẹ, sibẹ o tẹsiwaju lati ko ipa pataki ninu iṣẹ atunṣe ni France. O ṣiṣẹ lati tan iyinrere kalẹ ni ilẹ abinibi rẹ ninu awọn ọdun ti o kọkọ lo ni ilẹ ajeji. O lo ọpọlọpọ akoko lati waasu si awọn eniyan ilu rẹ ti wọn wa ni ẹnu ibode, nibi ti o ti n woye ijakadi naa laisimi, ti o si ran an lọwọ pẹlu ọrọ igbaniyanju ati amọran rẹ. Pẹlu iranlọwọ awọn miran ti wọn sa kuro ni ilu, a ṣe itumọ awọn iwe awọn Alatunṣe ti ilẹ Germany si ede ilu France, a si tẹ wọn jade ni ọpọ yanturu pẹlu Bibeli ni ede French. Awọn tawetawe ta awọn iwe wọnyi daradara ni France. A ta wọn ni owo kekere fun awọn tawetawe wọnyi, èrè ti wọn ri lori wọn si ran wọn lọwọ lati tẹsiwaju.

Farel bẹrẹ iṣẹ rẹ ni Switzerland gẹgẹ bi olukọ otoṣi kan. O lọ si agbegbe kan ti o farasin, o bẹrẹ si i kọ awọn ọmọde. Ni afikun si awọn ẹka ẹkọ ti wọn n kọ, o rọra n fi awọn otitọ inu Bibeli kọ wọn, o ni ireti wipe oun yoo de ọdọ awọn obi nipasẹ awọn ọmọ. Awọn kan wa ti wọn gbagbọ, ṣugbọn awọn alufa wa da iṣẹ naa duro, awọn eniyan ilu alaimọkan naa si dide lati tako o. Awọn alufa n wipe, “Eyi ko le jẹ iyinrere Kristi, nitori pe iwaasu rẹ kii mu alaafia wa, bikoṣe ogun.” Bii ti awọn ọmọ ẹyin akọkọ, bi a ba ṣe inunibini si wọn ninu ilu kan, wọn sa lọ si omiran. Lati ileto de ileto, lati ilu de ilu, o lọ, o n fi ẹsẹ rin, o n fi ebi, otutu ati ikaarẹ mọra, ẹmi rẹ si wa ninu ewu ni ibi gbogbo. O waasu ni aarin ọja, ninu awọn ile ijọsin, ati ni igba miran, lori pẹpẹ iwaasu awọn katidra. Ni igba miran, a ri ti ko ni si olugbọ kankan ninu ile ijọsin, ni igba miran ẹwẹ, wọn a fi ariwo ati yẹyẹ ṣiṣe di iwaasu rẹ lọwọ; ni igba miran a a fi ipa wọ kuro lori pẹpẹ iwaasu. Ki i ṣe ẹẹkan pere ni awọn ọmọ ita kọlu u ti wọn si fẹrẹ lu u de oju iku. Sibẹ o tẹsiwaju. Bi o tilẹ jẹ wipe a saba maa n le pada, pẹlu iforiti ti ko kaarẹ, á tun pada sibẹ; ni menimeji, o ri ti awọn ilu ti wọn ti gbọrẹgẹtigẹ ninu ẹsin popu n ṣi ilẹkun wọn silẹ fun iyinrere. Laipẹ,

agbegbe kekere ti o ti kọkọ bẹrẹ iṣẹ rẹ gba igbagbọ ti a tunṣe naa. Awọn ilu Morat ati Neuchatel tun kọ aṣa Romu silẹ, wọn si ko awọn ere ibọrisa kuro ninu awọn ile ijọsin wọn.

O ti pẹ ti Farel ti fẹ lati fi asia Protestant sọlẹ ni Geneva. Bi a ba le jere ilu yii, yoo jẹ olu ile iṣẹ fun iṣẹ Atunse ni France, ni Swizerland ati ni Italy. Pẹlu ero yii niwaju rẹ, o tẹsiwaju titi ti o fi jere ọpọ awọn ilu ati ileto ti wọn wà layika. Pẹlu olubakọworin kan ṣoṣo, o wọ ilu Geneva lọ. Ṣugbọn iwaasu meji pere ni a gba a laaye lati wa. Lẹyin ti awọn alufa ṣe akitiyan ki aṣẹ ijọba o da lẹbi, ṣugbọn ti ko bọ si, wọn wa pe e siwaju igbimọ ijọ, wọn wá sibẹ pẹlu awọn ohun ija olóró ti wọn kó pamọ si abẹ aṣọ wọn, wọn pinu lati gba ẹmi rẹ. Awọn ọmọ ita pejọ pẹlu ida ati kumọ si ita lati ri wipe, bi o ba sá asala kuro ninu igbimọ, wọn yoo ri wipe o ku. Ṣugbọn nitori awọn adajọ ati awọn ologun ti wọn wa nibe, a da ẹmi rẹ si. Ni aarọ kutukutu ọjọ keji, a mu oun ati ekeji rẹ kọja ibi adagun omi kan lọ si ibi aabo. Bayi ni ipa rẹ akọkọ lati jere ọkan Geneva ṣe pari.

Fun igba keji, ohun elo ti ko niyi to ni a yàn—ọdọmọkunrin kan, ti irisi rẹ ko fanimọra rara debi pe awọn ti wọn pe ara wọn ni ọrẹ iṣẹ atunṣe gan ko ṣe si daradara. Ṣugbọn ki ni iru ẹni yii le ṣe nibi ti a ti kọ Farel silẹ? Bawo ni ẹni ti igboya ati iriri rẹ ko pọ yii ṣe le doju kọ iji ti o le awọn alagbara ati akikanju julọ sa? “Ki i ṣe nipa ipa, tabi nipa agbara, bikoṣe nipa Ẹmi Mi ni Oluwa wi.” Sekaraya 4:6. “Ọlọrun ti yan awọn ohun alailagbara aye lati doju ti awọn alagbara.” “Nitori ailera Ọlọrun lagbara ju eniyan lọ.” I Kọrintin 1:27, 25.

Froment bẹrẹ iṣẹ rẹ gẹgẹ bi olukọ. Otitọ ti o ba kọ awọn ọmọ ni ile ẹkọ, wọn a tunsọ ni ile. Laipẹ, awọn obi n wa lati gbọ alaye Bibeli titi ti yara ikawe naa fi kun fun awọn akẹkọ. A pin Majẹmu Tuntun ati awọn iwe ilewọ lọfẹ, wọn si de ọdọ awọn ti ko to bẹẹ lati jade si gbangba lati wa gbọ awọn ikọni tuntun wọnyi. Lẹyin igba diẹ, o tun di dandan fun oṣiṣẹ yii lati salọ; ṣugbọn awọn otitọ ti o fi kọni wa ninu ọkan awọn eniyan. A ti gbin iṣẹ Atunṣe silẹ, o si tẹsiwaju lati lokun, ti o si n tan kalẹ si. Awọn oniwaasu naa pada wa, nipaṣẹ iṣẹ wọn, ẹsin Protestant fi ẹsẹ mulẹ ni Geneva nikẹyin.

Ilu naa ti jẹwọ Iṣẹ Atunṣe nigba ti Calvin, lẹyin ọpọlọpọ irinkiri ati ayipada ninu igbesi aye rẹ, wọ inu rẹ lọ. Nigba ti o n pada bọ ninu ibẹwo ti o ṣe kẹyin si ilẹ abinibi rẹ, ni oju ọna lọ si Basel, o ri awọn ẹgbẹgun Charles V ni oju ọna ti o lọ taara, eyi si jẹ ki o di dandan fun lati gba ọna Geneva ti o ṣe kọrọ.

Ninu ibẹwo yii, Farel ri ọwọ Ọlọrun. Bi o tilẹ jẹ wipe Geneva ti gba igbagbọ ti a fọ mọ, sibẹ, iṣẹ nla si wa nibẹ lati ṣe. Ki i ṣe gẹgẹ bi ilu, bikoṣe gẹgẹ bi ẹnikọọkan ni a n yi pada si Ọlọrun; agbara Ẹmi Mimọ

nilati ṣe iṣẹ iyipada ninu ọkan ati ẹmi, ki i si i ṣe nipasẹ aṣẹ igbimọ. Nigba ti awọn ara Geneva ti kọ aṣẹ Romu silẹ, wọn ko ṣetan lati kọ awọn iwa ibajẹ ti wọn wọpọ labẹ akoso rẹ silẹ. Ki i ṣe iṣẹ kekere ni lati fi idi ilana mimọ ti iyinrere mulẹ, ati lati pese awọn eniyan wọnyi silẹ lati duro si ipo ti Ọlọrun pe wọn si.

Farel ni igboya wipe oun ri ninu Calvin ẹni ti o le so pọ mọ ara rẹ ninu iṣẹ yii. O rọ ọdọmọde ajiyinrere naa ni orukọ Ọlọrun lati duro ki o si ṣiṣẹ nibi. Calvin fi ibẹru fasẹyin. Ẹni ti o n tiju ti o si fẹran alaafia, o sa fun ibaṣepọ pẹlu igboya, ominira ati iwa ipa awọn ara Geneva. Ailera rẹ, pẹlu iwa rẹ lati maa kawe mu ki o fẹran lati maa danikan wa. Pẹlu igbagbọ rẹ wipe ohun le ṣe atilẹyin fun iṣẹ atunṣe pẹlu gègé ikọwe oun, o fẹ lati lọ si ibi idakẹrọrọ lati kawe, ati nipasẹ ile itẹwe, yoo gba awọn ijọ niyanju, yoo si gbe wọn ro. Ṣugbọn ipẹ Farel wa si ọdọ rẹ gẹgẹ bi ipe lati Ọrun, ko si gbọdọ kọ ọ. O sọ wipe, o dabi ẹnipe, “A na ọwọ Ọlọrun silẹ lati ọrun, o di oun mu, o si fi oun si ibi ti oun ti fẹ yara kuro kankan, laile kuro nibẹ.”

Ni akoko yii, ewu nla rọgba yi iṣẹ Protestant ka. Ifibu popu n bu ramuramu mọ Geneva, awọn orilẹ ede nla si n dun kukulaja mọ lati paarun. Bawo ni ilu kekere yii yoo ṣe doju ija kọ ijọba ẹsin alagbara ti o saba maa n fi ipa mu ki awọn ọba ati olotu ijọba o tẹriba? Bawo ni yoo ṣe koju awọn ọmọ ogun nla aye yii?

Kaakiri awọn ilẹ ti n ṣe ẹsin Kristẹni, awọn ọta alagbara n dun mọhuru mọhuru mọ ẹsin Protestant. Awọn iṣẹgun akọkọ ti iṣẹ Atunṣe ti koja, Romu wa ko awọn agbara tuntun jọ, o fẹ paarun. Ni akoko yii ni a da ẹgbẹ Jesuit, ẹgbẹ ti o nika julọ, ti ko ni ibẹru ofin, ti o si lagbara julọ ninu awọn olugbeja ẹsin popu silẹ. Wọn yọ ara wọn kuro ninu gbogbo ifẹ aye ati ibatan eniyan, wọn di oku si ifẹ eniyan, wọn pa iṣọwọronu ati ẹri ọkan lẹnu mọ patapata, wọn ko mọ aṣẹ tabi ibatan kan, ayafi ti ẹgbẹ wọn, wọn ko si ni ojuṣe kan ayafi lati tan agbara rẹ kalẹ. Iyinrere Kristi fun awọn atẹle rẹ lagbara lati doju kọ ewu, lati fi ara da ijiya, lati maṣe bẹru òtutu, ebi, wahala, ati aini, lati gbe ọpagun otitọ soke loju ijiya, tubu ati idanasunni. Lati le doju kọ awọn agbara wọnyi, ẹgbẹ Jesuit fi igbonara aimọkan kọ awọn atẹle rẹ, eyi ti o fun wọn ni okun lati le fi ara da iru awọn ewu kan naa, ati lati le doju kọ agbara otitọ pẹlu gbogbo ohun ija ẹtan. Ko si iwa ọdaran ti o tobi julọ fun wọn lati wu, ko si irọ kan ti o buru ju lati pa, ko si ohun ti o nira ju fun wọn lati fi ara we. Wọn jẹ ẹjẹ lati jẹ otoṣi ati alaini titi lae, erongba wọn ni lati ni ọrọ ati agbara, lati fi ara wọn jin fun iṣubu ẹsin Protestant, ki wọn si fi idi aṣẹ popu mulẹ lẹẹkan sii.

Nigba ti wọn ba fi ara han gẹgẹ bi ọmọ ẹgbẹ wọn, wọn a wọ aṣọ iwa mimọ, wọn a bẹ ọgba ẹwọn ati ile iwosan wo, wọn a ṣe itọju

alaisan ati alaini, wọn n kede wipe wọn ti kọ aye silẹ, wọn si ti gba orukọ mimọ ti Jesu, Ẹni ti O rin kaakiri lati ṣe rere. Ṣugbọn erongba iwa ọdaran ti o buru jai ni wọn fi pamọ si abẹ iwa alailẹgan yii. Ẹkọ ipilẹ ẹgbẹ naa ni wipe ayọrisi nnkan yoo ṣe idalare ọna ti a gba ṣe e. Pẹlu ofin yii, ki i ṣe wipe irọ pipa, ole jija, ibura eke, ipaniyan jẹ awọn iwa ti a le fi oju fo da nikan, ṣugbọn a le gboriyin fun wọn bi wọn ba ṣiṣẹ fun ifẹ ijọ. Ni abẹ orişirişi iboju, wọn a dé awọn ipo oṣelu, wọn a goke agba dé ipo oludamọran ọba, wọn a si ṣe awọn ofin orilẹ ede. Wọn a ṣiṣẹ bi iranṣẹ lati le jẹ amí lori ọga wọn. Wọn da ile ẹkọ silẹ fun awọn ọmọ ọba ati ijoye, wọn tun da ile ẹkọ silẹ fun awọn eniyan lasan; a si n jẹ ki awọn ọmọ ti obi wọn n ṣe ẹsin Protestant o maa bọwọ fun awọn ilana ẹsin popu. Gbogbo ogo ati iwuga ẹsin Romu dà wọn niye rú, á sì gbà wọn lọkan, bayi ni awọn ọmọ ṣe ṣe iku pa ominira ti awọn baba wọn jiya ti wọn tun ta ẹjẹ silẹ lati gba. Awọn ọmọ ẹgbẹ Jesu yara kankan tan ka ilẹ Europe, nibikibi ti wọn ba si lọ, isọji ẹsin popu maa n tẹle ni.

Lati le fun wọn ni agbara si, a pa aṣẹ ti o da igbimọ igbẹjọ ti o n ri si ohun ti eniyan gbagbọ silẹ lẹẹkan si. Bi o tilẹ jẹ wipe gbogbo awọn eniyan ni wọn korira rẹ, ani ni awọn orilẹ ede ti wọn n ṣe ẹsin Katoliki paapa, awọn adari ẹsin popu tun gbe igbimọ ẹlẹru naa kalẹ lẹẹkan si, ti wọn si n wu awọn iwa ti o buru jai ju eyi ti a le fi han lọ ninu awọn ile tubu rẹ. Ni ọpọlọpọ awọn orilẹ ede, ẹgbẹẹgbẹrun awọn ọdọ orilẹ ede, awọn oniwa alailabawọn, awọn ẹni iyì, awọn amoye ati ọlọgbọn, awọn alufa olufọkansin ti wọn jẹ oniwabiọlọrun, awọn ara ilu ti wọn ni aapọn, ti wọn tun fẹran orilẹ ede wọn, awọn olukọ ti wọn ja fafa, awọn oluyaworan ti wọn dangajia, awọn onişẹ ọwọ ti wọn ni òye, ni a pa tabi ti wọn salọ si awọn ilẹ miran.

Awọn ọna ti Romu lo lati pa ina iṣẹ Atunṣe niyii, lati mu Bibeli kuro ni ọdọ awọn eniyan, ati lati da aimọkan ati igbagbọ asan ti akoko oju dudu pada. Ṣugbọn labẹ ibukun Ọlọrun ati iṣẹ awọn ẹni pataki ti O gbe dide lati rọpo Luther wọnyi, iṣẹ Protestant ko ṣubu. Ki i ṣe ọdọ ohun ija tabi oju rere awọn ijoye ni o ti ri agbara rẹ. Awọn orilẹ ede ti wọn kere julọ, awọn orilẹ ede ti wọn ko lọrọ ti wọn ko si lagbara julọ ni wọn di ile agbara rẹ. Geneva kekere laarin awọn orilẹ ede nla ti wọn n pete lati pa a run; Holland ni eti bebe okun ni iha ariwa, ti o n jijadu ni atako si iwa ipa Spain, ijọba ti o lagbara, ti o si lọrọ julọ nigba naa; orilẹ ede Sweden ti o jẹ aṣaaju, ti o si motutu, ni wọn gba iṣẹgun fun iṣẹ Atunṣe.

Fun bi ọgbọn ọdun, Calvin ṣiṣẹ ni Geneva, ni akọkọ, lati da ijọ ti yoo tẹle ilana iwuwasi ti Bibeli silẹ, ati lati jẹ ki iṣẹ Atunṣe o tẹsiwaju ni gbogbo Europe. Iṣẹ rẹ gẹgẹ bi alaṣẹ ilu ni abuku tirẹ, bẹẹ ni awọn

ikọni rẹ ni aṣiṣe ti wọn. Ṣugbọn o wulo ni titan awọn otitọ ti wọn ṣe pataki ni akoko tirẹ kalẹ, ni titẹle awọn ikọni ẹsin Protestant ni atako si ilana popu ti o n yara pada wa kankan, ati ni wiwaasu iwa mimọ ati igbe aye otitọ ninu awọn ijọ ti a fọ mọ, dipo igberaga ati iwa ibajẹ ti wọn wọpọ labẹ ikọni Romu.

Awọn iwe ateṣejade ati olukọ jade lati Geneva lati lọ tan awọn ikọni ti a fọmọ kalẹ. Gbogbo awọn ti a n ṣe inunibini si ni ilẹ gbogbo n wo ibi fun ikọni, imọran ati igbaniyanju. Ilu Calvin di ibi aabo fun awọn Alatunṣe ti a n dọdẹ kiri ni gbogbo iha iwọ oorun Europe. Ni sisa fun iji lile ti o tẹsiwaju fun igba pipẹ, awọn isansa wọnyi wa si ẹnu ọna Geneva. Ebi n pa wọn, a pa wọn lara, wọn ko ni ilẹ tabi ará, a gba wọn pẹlu idunnu, a si fi pẹlẹkutu ṣe itọju wọn; wọn ri ibugbe nibẹ, wọn bukun ilu ti o gba wọn sile pẹlu imọ, ẹkọ ati ifọkansin wọn. Ọpọ awọn ti wọn wa aabo wa sibẹ pada si ilẹ wọn lati dojukọ iwa onroro Romu. John Knox, Alatunṣe onigboya ti ilu Scotch, ọpọ awọn Puritans ti ilẹ Gẹẹsi, awọn Protestant ti Holland, ati Spain, awọn Huguenots ti France gbe imọlẹ otitọ lati Geneva lati lọ tan an si okunkun ilẹ abinibi wọn.

13

Netherlands Ati Scandinavia

Iwa onroro popu tete mu ifẹhonu ti o nipon wa ni Netherlands. Ni ọdẹgbẹrin (700) ọdun ṣaaju akoko Luther, awọn bịṣọbu meji ti a ran gẹgẹ bi aṣoju ọba lọ si Romu yọ popu loye laibẹru nigba ti wọn mọ iru iwa ti wọn n wu ni "agbegbe mimọ" naa: Ọlọrun "ti pese fun ijọ, ayaba ati iyawo Rẹ, ipese ainipẹkun ti o ṣe pataki fun idile rẹ, pẹlu owo ori ti ko le ṣa tabi dibajẹ, O ti fun ni ade ati ọpa aṣẹ ainipẹkun; . . . ohun gbogbo ti o n ṣeni loore ni o gba gẹgẹ bi olè. O gbe ara rẹ kalẹ ninu tẹmpili Ọlọrun; dipo gẹgẹ bi oluṣọ aguntan, o di kọlọkọlọ fun agbo aguntan; . . . wa a fẹ ki a gbagbọ wipe iwọ ni bịṣọbu ti o ga julọ, ṣugbọn o n wuwa gẹgẹ bi onroro. . . . Bi o tilẹ jẹ wipe o yẹ ki o wuwa bi iranṣẹ awọn iranṣẹ, bi o ti n pe ara rẹ, o n ṣe akitiyan lati jẹ oluwa awọn oluwa. . . . O sọ ofin Ọlọrun di asan. . . . Ẹmi Mimọ ni O n kọ ijọ ni gbogbo aye. . . . Ilu Ọlọrun wa, ọmọ ibi ti awa n ṣe, de gbogbo ọrun; o si tobi ju ilu ti awọn woli mimọ pe ni Babiloni, ti o n fi ara rẹ han bi ẹni mimọ, ti o fẹ ki ọrun o tẹwọ gba oun, ti o si n fọnnu wipe oun ni ọgbọn ayeraye; nikẹyin, laisi idi kankan fun, ti o n sọ wipe, ohun ko baku ri, bẹẹ ni ko le baku."

Awọn miran dide lati ọdun de ọdun lati ṣe iru atako yii. Awọn olukọ akoko wọnyẹn, ti wọn la orịṣirịṣi ilẹ kọja, ti wọn n jẹ orịṣirịṣi orukọ, fi ara jọ awọn ajere ọkan ti Vadois, ti wọn tan imọ iyinrere ka ibi gbogbo, wọn de Netherlands. Awọn ikọni wọn yara tan kalẹ kankan. Wọn tumọ Bibeli awọn Waldens lẹsẹẹsẹ si ede Dutch. Wọn sọ wipe "anfani ti o pọ wa ninu rẹ; ko si ẹfẹ, itan arosọ, ọrọ asan, bikoṣe awọn ọrọ otitọ; lootọ a le tete ri awọn ohun ti wọn ni itumọ nihin lọhun, ṣugbọn eyi ti o ṣe pataki, ti o si dun julọ ninu awọn ohun ti o dara ti

wọn si jẹ mimọ ni a le ri ninu rẹ.” Ohun ti awọn ọrẹ igbagbọ atijọ kọ silẹ niyi ni ọrundun kejila.

Awọn inunibini Romu wa bẹrẹ; ṣugbọn laarin ina ati ijiya awọn onigbagbọ tubọ n pọ si, wọn n fi iduroṣinṣin kede wipe Bibeli ni aṣẹ ti ko le baku ninu ẹsin, ati wipe “a ko gbọdọ fi ipa mu ẹnikẹni lati gbagbọ, ayafi nipa wiwaasu.”

Awọn ikọni Luther ri ilẹ ti o dara ni Netherlands, awọn eniyan olootọ ati olufọkansin si dide lati waasu iyinrere. Ọkan lara awọn agbegbe Holland ni Menno Simons ti jade wa. A kọ ni ilana Roman Katoliki, a si gbe ọwọ le lori gẹgẹ bi alufa, o jẹ alaimọkan patapata nipa Bibeli, ko si ni ka a nitori ki a ma baa tan an jẹ sinu ẹkọ odi. Nigba ti o ṣe iyemeji nipa ikọni wipe akara ati waini ounjẹ alẹ Oluwa jẹ ara ati ẹjẹ Oluwa gan an, o ri i gẹgẹ bi idanwo lati ọdọ Satani, o si wa ọna lati yọ ara rẹ kuro ninu rẹ pẹlu adura ati ijẹwọ ẹṣẹ, ṣugbọn lasan ni. O ro lati pa ẹri ọkan rẹ ti n da lẹbi lẹnu mọ nipa lilọ si ibi itẹ ifẹkufẹ ara ẹni lọrun lainiwọntuwọnsi, ṣugbọn eyi ko ṣiṣẹ. Lẹyin igba diẹ, a dari rẹ lati kọ Majẹmu Tuntun, eyi, pẹlu awọn iwe Luther mu ki o gba igbagbọ ti a fọ mọ. Laipẹ, o ri ti a bẹ ọkunrin kan lori ni ileto kan ti o wa lẹgbẹ rẹ nitori pe o tun itẹbọmi ṣe. Eyi mu ki o kọ ẹkọ Bibeli nipa ṣiṣe itẹbọmi fun ọmọ jojolo. Ko le ri ẹri kankan fun ninu Iwe Mimọ, ṣugbọn o ri wipe ironupiwada ati igbagbọ ni awọn ohun ti a nilo lati le ṣe itẹbọmi.

Menno kuro ninu ijọ Romu, o si fi ẹmi rẹ jin fun kikọni ni awọn otitọ ti o gba. Awọn ẹgbẹ onirokuro nipa ẹsin kan dide ni Germany ati Netherlands ti wọn kọ awọn ikọni kan ti ko bojumu ti wọn si le fa iṣọtẹ, wọn n fa idarudapọ ati ailétò, wọn si n da ija ati iṣọtẹ silẹ. Menno ri ohun ti awọn ẹgbẹ wọnyi yoo yọri si, o si ṣiṣẹ takuntakun lati tako awọn ẹkọ eke ati ète buburu awọn elerokero ẹsin wọnyi. Ọpọlọpọ awọn eniyan ni awọn elerokero yii ti ṣi lọna, ṣugbọn ti wọn kọ awọn ikọni buburu wọn silẹ; awọn ọmọọmọ awọn Kristẹni igba atijọ si wa nibẹ pẹlu, awọn eso ikọni awọn Waldens. Menno ṣiṣẹ laarin awọn wọnyi pẹlu itara nla o si ṣe aṣeyọri nla.

Fun ọdun marundinlogun, o rinrin ajo, pẹlu iyawo ati awọn ọmọ rẹ, o n fi ara da inira ati ijiya, o n wa ninu ewu ni ọpọ igba. O lọ si Netherlands ati iha ariwa Germany, o n ṣiṣẹ ni pataki julọ laarin awọn alaini, ṣugbọn ipa rẹ n pọ si. O ni ẹbun ọrọ sisọ, bi o tilẹ jẹ wipe ko kawe pupọ, o jẹ ẹni ti ko le yẹsẹ kuro ninu ohun ti o gbagbọ, o ni ẹmi irẹlẹ ati iwa apẹlẹ, o jẹ olootọ ati olufọkansin, o n fi awọn ohun ti o kọni han ninu igbesi aye rẹ, awọn eniyan si ni igbẹkẹle ninu rẹ. A fọn awọn atẹle rẹ kaakiri, a si fiya jẹ wọn. Wọn jiya pupọpupọ nitori ti a ko wọn pọ mọ awọn elerokero ẹsin ti Munsterites. Sibẹ ọpọ awọn eniyan ni wọn yipada nitori iṣẹ rẹ.

Ko si ibi ti a ti gba ikọni ti a tunṣe yii bii ni Netherlands. Orilẹ ede perete si ni awọn atẹle rẹ ti jiya inunibini bi i ti ibẹ. Charles V fi ofin de iṣẹ Atunṣe ni Germany, i ba si fi tayọtayọ dana sun gbogbo awọn atẹle rẹ bi ki i ba i ṣe awọn ijoye ti wọn duro gẹgẹ bi idiwọ fun iwa onroro rẹ. Agbara rẹ po gan ni Netherlands, aṣẹ inunibini si n tẹle ara wọn ni sisẹ n tẹle. Lati ka Bibeli, lati gbọ tabi lati waasu rẹ, tabi lati sọrọ nipa rẹ mu ijiya iku nipa idanasunni wa. Lati gba adura si Ọlọrun ni ikọọkọ, lati kọ lati tẹriba fun ere, tabi lati kọ Saamu tun fa ijiya iku. Ani a tun da awọn ti wọn ba kọ aṣiṣe wọn silẹ lẹbi, bi o ba jẹ ọkunrin, yoo ku nipa ida; bi o ba jẹ obinrin, a yoo sin in laaye. Ọpọ ni wọn ṣegbe labẹ ijọba Charles ati Philip II.

Ni akoko kan, a ko gbogbo idile kan wa siwaju igbimọ ti n ṣe igbẹjọ nipa ohun ti eniyan gbagbọ, a fi ẹsun kan wọn wipe wọn ko wa si mass mọ, wọn si n jọsin ninu ile. Nigba ti a beere lọwọ wọn nipa ohun ti wọn maa n ṣe ni ikọọkọ, ọmọkunrin wọn ti o kere julọ dahun wipe: “A maa n wolẹ, a si n gbadura ki Ọlọrun o lawa loye, ki O si dari ẹṣẹ wa jiwa; a maa n gbadura fun ọba wa, ki iṣakoso rẹ le ni alaafia ki aye rẹ si layo; a maa n gbadura fun awọn alaṣẹ wa ki Ọlọrun o pa wọn mọ.” Eyi fi ọwọ ba awọn adajọ diẹ lọkan, sibẹ wọn da baba ati ọkan ninu awọn ọmọ rẹ ni ẹjọ iku ina.

Ibinu awọn oninunibini ba igbagbọ awọn ajẹriku dọgba. Ki i ṣe awọn ọkunrin nikan bikoṣe ati awọn obinrin ẹlẹgẹ ati awọn ọdọmọbinrin pẹlu ni wọn fi igboya ti ko lẹgbẹ han. “Awọn iyawo a duro si ẹgbẹ igi ti a de ọkọ wọn mọ, nigba ti wọn ba n jẹ irora ina, wọn a sọ ọrọ itunu fun wọn, tabi ki wọn kọ Saamu lati mu inu wọn dun.” “Awọn ọdọmọbinrin yoo dubulẹ sinu saare wọn laaye bi ẹni ti n wọ inu yara lati sun orun alẹ; tabi ki wọn lọ si ibi ibẹnilori ati inu ina, wọn a wọ aṣọ wọn ti o dara julọ, bi awọn ti n lọ si ibi igbeyawo wọn.”

Bii ti akoko ti ẹsin ibọrisa fẹ pa iyinrere run, ẹjẹ awọn Kristẹni jẹ irugbin. Inunibini ṣiṣẹ lati jẹ ki iye awọn ajẹri fun otitọ o pọ si ni. Awọn ọba ti o dùn wọ inu eegun nitori ipinu awọn eniyan ti ko ṣe e bori jẹ ki iṣẹ buburu yii o tẹsiwaju lati ọdun de ọdun; ṣugbọn lasan ni. Labẹ William ti Orange, ẹni rere, idoju ijọba bolẹ fun Holland ni ominira lati jọsin Ọlọrun nikẹyin.

Ẹjẹ awọn ọmọ ẹyin ni o ṣe afihan itẹsiwaju iyinrere ni awọn oke Piedmont, ni pẹtẹlẹ France, ati ni eti bebe Holland. Ṣugbọn ni awọn orilẹ ede ti iha ariwa, o wọle pẹlu alaafia. Awọn ọmọ ile ẹkọ lati Wittenberg ti wọn n pada si ile wọn mu igbagbọ ti a tunṣe wa si Scandinavia. Awọn iwe Luther tun tan imọlẹ naa ka. Awọn eniyan lasan, alagidi ti iha ariwa yipada kuro ninu iwa ibajẹ, igberaga, ati

igbagbọ asan Romu wọn si tẹwọ gba iwa mimọ, ainiwahala ati otitọ ti n funni ni iye ti Bibeli.

Tausen "Alatunse ti Denmark" jẹ ọmọ agbẹ. Ọdọmọkunrin naa tètè fi òye ti o ja fafa han; o poungbẹ fun ẹkọ; ṣugbọn ipo ti awọn obi rẹ wa ko jẹ ki o ṣe e ṣe fun lati ri eyi, nitori naa, o wọ ile awọn ajẹjẹ ẹsin lọ. Nibi, iwa mimọ igbesi aye rẹ, pẹlu imurasiṣe ati iṣotitọ rẹ mu ki awọn ọga rẹ o fẹran rẹ. Ayẹwo fihan wipe o ni ẹbun ti yoo jẹ ki o wulo fun ijọ ni ọjọ iwaju. A wa pinu lati ran an lọ kọ ẹkọ ni ọkan ninu awọn ile ẹkọ giga ti o wa ni Germany tabi Netherlands. A fun ọdọmọde akẹkọ yii ni anfani lati yan ile ẹkọ funra rẹ, ṣugbọn lori idi kan wipe ko gbọdọ lọ si Wittenberg. A ko gbọdọ jẹ ki majele ẹkọ odi o wu ọmọwe ijọ lewu. Bẹẹ ni awọn ajẹjẹ ẹsin wi.

Tausen lọ si Cologne, eyi ti o jẹ ọkan lara awọn ile iṣọ agbara ẹsin Romu nigba naa gẹgẹ bi o ti wa loni. Laipẹ, iṣọwọmọ Ọlọrun nipasẹ adura ati iṣaṣaro awọn olukọ nibi su. Laarin akoko kan naa ni o ri awọn iwe Luther. O ka wọn pẹlu iyalẹnu ati idunnu, o si fẹ lati jẹgbadun idanilẹkọ lọdọ Alatunṣe naa. Ṣugbọn lati ṣe eyi tumọ si wipe yoo ṣẹ ọga rẹ ni ile ajẹjẹ ẹsin, yoo si padanu iranlọwọ rẹ. O ṣe ipinu rẹ laipẹ, ki o to pẹ ju, o ti fi orukọ silẹ gẹgẹ bi akẹkọ ni Wittenberg.

Nigba ti o pada si Denmark, o lọ si yara ajẹjẹ ẹsin rẹ. Ko si ẹni ti o funra si wipe o ti gba ẹkọ Luther; ko fi aṣiri rẹ han, ṣugbọn o ṣa ipa, lairu ibẹru awọn akẹgbẹ rẹ soke, lati dari wọn si igbagbọ ati igbesi aye ti o mọ si. O ṣi Bibeli, o si ṣe alaye awọn itumọ rẹ ni tootọ, nikẹyin, o waasu Kristi si wọn gẹgẹ bi ododo ẹlẹṣẹ ati ireti kan ṣoṣo ti o ni fun igbala. Ibinu ọga rẹ, ẹni ti o ti ni ireti giga ninu rẹ gẹgẹ bi akikanju olugbeja Romu, pọ jọjọ. Loju ẹsẹ, a mu kuro ninu ile ẹsin rẹ lọ si ibomiran, a si ti i mọ yara rẹ pẹlu iṣọ ti o nipọn.

Si ibẹru awọn ẹlẹṣọ rẹ tuntun diẹ lara awọn ajẹjẹ ẹsin sọ wipe awọn ti yipada di ẹlẹsin Protestant. Lati oju irin yara rẹ, Tausen sọ imọ otitọ fun awọn ẹlẹgbẹ rẹ. Bi o ba jẹ wipe awọn baba ti ilẹ Denmark wọnyẹn ni oye bi ijọ ti n ṣe si ẹkọ odi ni, a ba ma tun gbọ ohùn Tausen mọ lae; ṣugbọn dipo ki wọn ti i mọ inu ile kan labẹ ilẹ, wọn le e kuro ninu ile ẹsin wọn. Wọn wa di alailagbara ni akoko yii. Aṣẹ ọba ti a ṣẹṣẹ ṣe daabo bo awọn olukọ ikọni tuntun naa. Tausen bẹrẹ si ni i waasu. A ṣi awọn ile ijọsin silẹ fun, awọn eniyan si n rọ lọ lati gbọ ọ. Awọn miran pẹlu n waasu ọrọ Ọlọrun. A ṣe itumọ Majẹmu Tuntun si ede Denmark, a si pin in kaakiri. Akitiyan ti awọn ẹlẹsin popu n ṣe lati bi i lulẹ n ṣiṣẹ lati tan an kalẹ si ni, ko si pẹ pupọ ti Denmark tẹwọ gba igbagbọ ti a fọ mọ.

Ni Sweden bakan naa, awọn ọdọmọkunrin ti wọn ti mu lati inu kanga Wittenberg gbe omi iye lọ fun awọn ara ilu wọn. Meji ninu

awọn adari iṣẹ Atunṣe ni ilẹ Sweden ni Olaf ati Laurentius Petri, ọmọ agbẹdẹ ti Orebro, ti wọn kẹkọ labẹ Luther ati Melancthon, wọn si fi tọkantọkan kọni ni otitọ ti wọn gba. Bii ti Alatunṣe nla naa, Olaf ru awọn eniyan soke pẹlu itara ati ẹbun isọrọ rẹ, nigba ti Laurentius, bi i ti Melancthon jẹ ọmọwe, ti o n ronu, ti o si ni iwa tutu. Awọn mejeeji jẹ olufọkansin tootọ, wọn ni imọ ti o ga nipa ẹkọ ọrọ Ọlọrun, wọn si ni igboya ti ko le yẹ ninu titan otitọ kalẹ. Atako awọn ẹlẹsin ijọ padi ko baku. Awọn alufa Katoliki ru awọn eniyan alaimọkan ti wọn gba ohun asan gbọ soke. Awọn ero saba maa n kọlu Olaf Petri, ni awọn akoko diẹ, pẹlu agbara ni o fi sa asala fun ẹmi rẹ. Ṣugbọn ọba fi oju rere wo awọn Alatunṣe wọnyi, o si daabo bo wọn.

Labẹ akoso ijọ Romu, awọn eniyan tẹri sinu aini ti inira si n lọ wọn mọlẹ. Wọn ko ni Iwe Mimọ; nitori ẹsin wọn ko kọja ami ati iṣẹ isin ti ko fun ọkan ni imọlẹ, wọn n pada sinu igbagbọ asan ati isin abọrisa ti awọn baba wọn, ti ko gba Ọlọrun gbọ. Orilẹ ede naa pin si orisirisi ẹgbẹ ti wọn n ba ara wọn ja, ti ija aidẹyin wọn si pa kun ijiya gbogbo wọn. Ọba pinu lati ṣe iṣẹ atunṣe ninu ilu ati ijọ, o si tẹwọgba awọn oluranlọwọ ti wọn kun oju oṣuwọn wọnyi ninu ija rẹ lati tako Romu.

Niwaju ọba ati awọn eniyan pataki ni Sweden, Olaf Petri gbeja awọn ikọni ti a tunṣe pẹlu agbara nla ni atako si awọn aṣoju Romu. O sọ wipe a yoo gba awọn ikọni awọn Baba ijọ nigba ti wọn ba wa ni ibamu pẹlu Iwe Mimọ, wipe a ti fi awọn ikọni igbagbọ ti wọn ṣe pataki han ninu Bibeli ni ọna ti o han kedere ti o si yeni yekeyeke, ki gbogbo eniyan baa le ni oye rẹ. Kristi wipe, "Ikọni mi ki i ṣe temi, bikoṣe ti Ẹni ti o ran mi" (Johanu 7:16); Pọlu tun sọ wipe oun yoo di ẹni egun bi oun ba waasu iyinrere miran ju eyi ti oun ti gba lọ (Galatia 1:8). Alatunṣe naa wa sọ wipe, "Ki lo wa de ti awọn miran fi ro wipe wọn le gbe awọn ikọni kalẹ bi wọn ti fẹ, ti wọn si gbe wọn kalẹ gẹgẹ bi ohun ti a nilo fun igbala?" O fihan wipe awọn aṣẹ ijọ ko ni agbara bi wọn ba tako aṣẹ Ọlọrun, o si tẹle ẹkọ nla ti Protestant wipe "Bibeli, ani Bibeli nikan" ni aṣẹ fun igbagbọ ati iṣesi.

Bi o tilẹ jẹ wipe a ṣe ariyanjiyan yii ni ibi ti ko lokiki, o fihan wa "iru awọn eniyan ti wọn wa ninu ẹgbẹ ogun awọn Alatunṣe. Wọn ki i ṣe ẹni ti ko mọwe, onijagidijagan ẹsin, tabi alariwo—rara, ko ri bẹẹ; wọn ti kọ ẹkọ ọrọ Ọlọrun, wọn si mọ bi wọn ti le lo ohun ija ti a fifun wọn ninu ile ohun ija Bibeli daradara. Nipa imọ ẹkọ, wọn ju akẹgbẹ wọn lọ. Bi a ba fi akiyesi wa si awọn ibi titayọ bii Wittenberg ati Zurich, ati si awọn orukọ pataki bii Luther ati Melancthon, Zwingli ati Oecolampadius, a maa n ri wipe o tọna bi a ba sọ fun wa wipe awọn adari inu ẹgbẹ yii niwọnyi, a a si ro wipe wọn a ni agbara nla ati ọrọ pupọ; ṣugbọn awọn atẹle wọn ko ri bẹẹ. Amọ a yiju si ibi ija

ti o farasin ni Sweden, ati orukọ ti ko lokiki bi i ti Olaf ati Laurentius Petri—lati ori awọn ọga titi de ori awọn ọmọ ẹyin—ki ni a ri? . . . “Awọn ọmọwe, ẹlẹkọ nipa ọrọ Ọlọrun, awọn ti wọn ti ni oye kikun nipa gbogbo ilana otitọ iyinrere, ti wọn n ri iṣẹgun lori awọn ọlọgbọn ẹwẹ ti ile ẹkọ ati ijoye Romu laijanpata.”

Nitori ariyanjiyan yii, ọba Sweden gba igbagbọ Protestant, laipẹ igbimọ orilẹ ede tẹwọ gba a pẹlu. Olaf Petri ti ṣe itumọ Majẹmu Tuntun si ede Sweden, nipa aṣẹ ọba, awọn arakunrin mejeeji naa si tumọ gbogbo Bibeli. Fun igba akọkọ, awọn eniyan Sweden gba ọrọ Ọlọrun ni ede abinibi wọn. Igbimọ orilẹ ede wa paṣẹ wipe ki gbogbo awọn alufa o ṣe alaye Iwe Mimọ, ki a si kọ awọn ọmọ ile iwe bi a ti n ka Bibeli.

Diẹdiẹ, ni ọna ti o si daju, imọlẹ alayọ ti iyinrere n gbá okunkun aimọkan ati igbagbọ asan lọ. Nigba ti o kuro ni abẹ inira Romu, orilẹ ede naa de ipo nla ati ipo agbara ti koi tii deri. Sweden di ọkan lara awọn ibi aabo fun ẹsin Protestant. Ọgọọrun ọdun lẹyin eyi, ni akoko ewu ti o buru julọ, orilẹ ede kekere ti ko lagbara tẹlẹ yii—ọkan ṣoṣo ni gbogbo Europe ti o gboya lati ṣe iranwọ—ni o wa gba Germany silẹ ninu wahala buburu ogun ti wọn ja fun ọgbọn ọdun. O dabi ẹnipe gbogbo iha ariwa Europe ti fẹ bọ si ọwọ iwa onroro Romu tan. Awọn ọmọ ogun Sweden ni wọn ran Germany lọwọ lati yi aṣeyọri awọn ẹlẹsin popu pada, lati gba ifarada fun awọn Protestant,—awọn atẹle Calvin, ati awọn atẹle Luther ,—ati lati da ominira ẹri ọkan pada sinu awọn orilẹ ede ti wọn ti gba iṣẹ Atunṣe.

14

Alatunṣe Ikẹyin Ni England

Bi Luther ti n ṣi Bibeli ti a pade silẹ fun awọn ara Germany, Ẹmi Ọlọrun n mi si Tyndale lati ṣe ohun kan naa fun England. Bibeli Latin ti o ni ọpọlọpọ aṣiṣe ni a fi ṣe itumọ Bibeli Wycliffe. A koi ti i tẹ ẹ jade lati inu ile itẹwe, ọwọ ẹda ti a fi ọwọ kọ ko po rara ti o fi jẹ wipe awọn perete ti wọn jẹ ọlọrọ ati awọn ijoye ni wọn le ni; siwaju si, nitori pe ijọ ti fi ofin ti o lagbara de e, ẹda rẹ ko po nita. Ni 1516, ọdun kan ṣaaju ki Luther to gbe awọn afiyesi rẹ sita, Erasmus ti tẹ ẹda Majẹmu Tuntun jade ni ede Greek ati Latin. Ni akoko yii fun igba akọkọ, a tẹ ọrọ Ọlọrun jade ni ede ti a fi kọ gan an. Gbogbo aṣiṣe awọn ẹda ti atẹyinwa ni a ṣe atunṣe si ninu iṣẹ yii, a tun kọ ọ ni ọna ti o yeni daradara. O jẹ ki ọpọ ninu awọn ọmọwe o ni oye otitọ ni ọna ti o dara si, o si fi okun fun iṣẹ atunṣe. Ṣugbọn pupọ ninu awọn ti ko kawe ni koi tii mọ nipa ọrọ Ọlọrun. Tyndale yoo pari iṣẹ Wycliffe nipa fifun awọn ara ilu rẹ ni Bibeli.

Akẹkọ ti n mura siṣẹ, ati ẹni ti n fi tọkantọkan wa otitọ, o gba iyinrere lati inu Majẹmu Tuntun ni ede Greek ti Erasmus ṣe. O waasu igbagbọ rẹ laibẹru, o fi n kọni wipe a nilati fi Iwe Mimọ dan gbogbo ikọni wo. Awọn atẹle popu n sọ wipe ijọ ni o funni ni Bibeli, ati pe ijọ nikanṣoṣo naa ni o le ṣe itumọ rẹ, ṣugbọn Tyndale dawọn lohun wipe: “Njẹ ẹ mọ ẹni ti o kọ awodi lati maa dọdẹ? Nitori naa, Ọlọrun ọun kan naa ni O kọ awọn ọmọ Rẹ ti ebi n pa lati wa Baba wọn ninu ọrọ Rẹ. Ẹyin kọ ni o fun wa ni Iwe Mimọ rara, ẹyin ni o pa a mọ kuro ni oju wa; ẹyin ni ẹ n sun awọn ti n waasu rẹ nina, bi o ba si ṣe e ṣe ni, ẹ ba sun Iwe Mimọ funra rẹ nina.”

Ọpọ eniyan ni wọn fi iye si iwaasu Tyndale; ọpọ si gba otitọ naa. Ṣugbọn awọn alufa kun fun iṣọra, ko pẹ ti o kuro nibi iṣẹ rẹ ti wọn

wa lati fi idẹruba ati ṣiṣe afihan ni ọna ti ko tọ ba iṣẹ rẹ jẹ. Ni ọpọ igba wọn maa n ṣe aṣeyọri. Á sọ wipe, “Kini a fẹ ṣe.” “Nigba ti a ba n funrugbin si ibi kan, ọta a wa ba ibi ti o ṣẹṣẹ fi silẹ jẹ. Mi o le wà ni ibi gbogbo. Ah! bi awọn Kristẹni ba ni Iwe Mimọ ni ede ara wọn, wọn a le doju kọ awọn ọlọgbọn ẹwẹ wọnyi. Laisi Iwe Mimọ, ko ṣe e ṣe lati fi ẹsẹ awọn ọmọ ijọ duro ninu otitọ.”

Erongba miran gba ọkan rẹ kan. O sọ wipe, “Èdè Israeli ni wọn fi n kọ Saamu ninu tẹmpili Jehofa; ṣe ko wa yẹ ki iyinrere o sọ ede ilẹ Gẹẹsi fun wa bi? . . . Ṣe o yẹ ki ijọ o ri imọlẹ ni afẹmọjumọ ju ọsan gangan lọ bi? . . . Awọn Kristẹni gbọdọ ka Majẹmu Tuntun ni ede abinibi wọn.” Ede aiyede bẹ silẹ laarin awọn ọmọwe ati olukọ ijọ. Nipasẹ Bibeli nikan ṣoṣo ni eniyan fi le ri otitọ. “Ọkan gba ọmọwe yii gbọ, ekeji gba omiran gbọ. . . . Awọn wọnyi tun wa n tako ara wọn. Bawo wa ni a ṣe le mọ ẹni ti o n sọ otitọ yatọ si ẹni ti ko sọ otitọ? . . . Nitootọ nipasẹ ọrọ Ọlọrun ni.”

Ko pẹ lẹyin eyi ti ọmọwe ọmọ ijọ Katoliki kan n ba ṣe ariyanjiyan, o sọ wipe: “O dara fun wa lati maṣe ni ofin Ọlọrun ju lati maṣe ni ofin popu lọ.” Tyndale da lohun wipe: “Mo tako popu ati gbogbo awọn ofin rẹ; bi Ọlọrun ba da ẹmi mi si, ni ọdun diẹ si, maa jẹ ki ọmọde ti n roko o mọ Iwe Mimọ ju o lọ.”

Erongba ti o bẹrẹ si ni i yan laayo, eyi ni lati fun awọn eniyan ni Majẹmu Tuntun ni ede abinibi wọn bẹrẹ si ni i wa si imuṣẹ, loju ẹsẹ o bẹrẹ iṣẹ naa. Inunibini le e kuro ni ile rẹ, o lọ si London, fun igba diẹ o ri aaye lati ṣe iṣẹ rẹ laisi idiwọ. Ṣugbọn inunibini awọn atẹle popu tun mu ki o sa kuro nibẹ. O dabi ẹnipe ilẹkun gbogbo England ti mọ, o wa pinu lati wa aabo ni Germany. Nibi ni o ti bẹrẹ titẹ Majẹmu Tuntun ni ede Gẹẹsi. Ẹẹmeji ni a da iṣẹ naa duro; ṣugbọn bi a ba di lọwọ ni ilu kan, a lọ si ibomiran. Nikẹyin, o lọ si Worms, nibi ti Luther ti wi awijare fun iyinrere niwaju igbimọ ni ọdun diẹ seyin. Ọpọ awọn ọrẹ iṣẹ Atunṣe ni wọn n gbe ninu ilu naa, Tyndale si tẹsiwaju ninu iṣẹ rẹ nibẹ laisi idiwọ mọ. A tẹ ẹgbẹrun mẹta Majẹmu Tuntun jade laipẹ, ẹda miran tun jade ni ọdun kan naa.

Pẹlu ifẹ ọkan ti o lagbara ati iforiti, o tẹsiwaju ninu iṣẹ rẹ. Bi o tilẹ jẹ wipe awọn alaṣẹ England ṣó ibudo igunlẹsi wọn pẹlu iṣọra ti o lagbara, ni orisirisi ọna ni a n gba gbe ọrọ Ọlọrun wọ inu London ni bonkẹlẹ, ti a si n pin kaakiri gbogbo orilẹ ede naa. Lasan ni awọn ẹlẹsin popu n ṣe lati tẹ otitọ rì. Ni igba kan, bisọbu ti Durham ra gbogbo Bibeli ti ontawe ti o jẹ ọrẹ Tyndale kan ni lori, pẹlu ero lati pa wọn run, o rò wipe eyi yoo di iṣẹ naa lọwọ jọjọ. Ṣugbọn dipo eyi, a lo owo naa lati ra awọn ohun elo ti a fi tẹ ẹda tuntun ti o tun dara si jade, eyi ti ki ba ti ṣe e ṣe, bikoba i se tori eyi. Nigba ti a wa ti Tyndale

mọle, a ṣe ileri lati da a silẹ bi yoo ba daruko awọn ti wọn n ran an lọwọ lati ri owo ti o fi n tẹ awọn Bibeli naa jade. O dahun wipe bisọbu ti Durham ṣisẹ ju ẹnikẹni lọ; nitori nipa sisan owo nla fun iwe ti o wa nilẹ, o ran an lọwọ lati tẹsiwaju pẹlu igboya.

A fi Tyndale han si ọwọ awọn ọta rẹ, ni igba kan, o wa ni atimọle fun ọpọ osu. Nikẹyin, o jẹri si igbagbọ rẹ pẹlu iku ajẹriku; ṣugbọn awọn ohun elo ti o pese silẹ ran awọn ọmọ ogun miran lọwọ lati tẹsiwaju ninu ija naa lati akoko yẹn titi di isinsinyii.

Latimer waasu lati ori pẹpẹ iwaasu wipe ede awọn eniyan ni o yẹ ki a maa fi ka Bibeli. O sọ wipe "Ọlọrun funra Rẹ" ni o kọ Iwe Mimọ; Iwe Mimọ si kopa ninu agbara ati iwa titi lae Ẹni ti o kọ ọ. "Ko si ọba, olotu ijọba, adajọ, ati alaṣẹ . . . ti ko ni ojuṣe lati ṣe igbọran si . . . ọrọ mimọ Rẹ." "Ẹ maṣe jẹ ki a gba ọna abuja kan, ṣugbọn ki ẹ jẹ ki ọrọ Ọlọrun o dari wa: ẹ maṣe jẹ ki a tọ ipasẹ awọn baba nla wa, tabi ki a wa ohun ti wọn wa, bikoṣe ohun ti o yẹ ki wọn ṣe"

Barnes ati Frith, ọrẹ Tyndale tootọ dide lati gbeja otitọ. Ridleys ati Cranmer tẹle. Awọn adari ninu isẹ Atunṣe ti ilẹ England jẹ ọmọwe, a gbe oriyin fun pupọ ninu wọn gẹgẹ bi awọn ti wọn ti goke agba ninu itara tabi ifọkansin ninu ẹsin Romu. Wọn tako ẹsin ijọ padi nitori imọ ti wọn ni nipa "ijọ mimọ" naa. Imọ ti wọn ni nipa awọn ohun ijinlẹ Babiloni fun ijẹri atako ti wọn ṣe si lagbara.

"Latimer sọ wipe, "Mo fẹ beere ibeere ti o ṣajeji kan." "Tani bisọbu ati alufa ti o mura sisẹ julọ ni England?. . . Mo ri wipe ẹ tẹti silẹ, ẹ fẹ ki n darukọ rẹ. . . . Ma a sọ fun yin: eṣu ni. . . . Ko jade kuro ninu agbegbe rẹ ri; nigbakugba ti ẹ ba wa, o maa n wa nile ni; . . . o maa n wa nibi isẹ rẹ. . . . Ẹ ko le ri laiṣe isẹ, mo fi da a yin loju. . . . Nibi ti eṣu n gbe, . . . ko ni si iwe nibẹ, bikoṣe abẹla; ko ni si Bibeli nibẹ, ṣugbọn ilẹkẹ a wa nibẹ; ko ni si imọlẹ iyinrere nibẹ; bikoṣe imọlẹ abẹla, ani ni ọsan gangan; . . . agbelebu Kristi a wá silẹ, ibi idaniloro awọn yọpoyọpo a wa sókè; . . . ko ni si dida aṣọ bo awọn to wa ni ihoho, awọn otoṣi, ati awọn alailagbara, bikoṣe siṣe awọn ère, ati awọn okuta lọṣọ; wọn a wo awọn ilana Ọlọrun ati ọrọ mimọ Rẹ lulẹ. . . . Ah bi awọn alufa wa ba le mura sisẹ lati gbin ọka ikọni rere bi Satani ti n gbin korofo ati asan!"

Ipilẹ ẹkọ nla ti awọn Alatunṣe wọnyi tẹle—ọkan naa ti awọn Waldenses, Wycliffe, John Huss, Luther, Zwingli, ati awọn ti wọn dara pọ mọ wọn gbagbọ—ni wipe Iwe Mimọ ni aṣẹ ti ko le baku fun igbagbọ ati iṣesi. Wọn ko gba ẹtọ awọn popu, igbimọ, awọn Baba ijọ, ati awọn ọba lati dari ọkan awọn eniyan lori ọrọ ẹsin. Bibeli ni aṣẹ wọn, ikọni rẹ ni wọn si fi dan gbogbo ikọni ati igbagbọ wo. Igbagbọ ninu Ọlọrun ati ọrọ Rẹ fun awọn eniyan mimọ wọnyi lokun bi wọn ti n fi ẹmi wọn lelẹ

nibi idanasunni. “Tu ara rẹ ninu” ni Latimer sọ fun ajẹriku ẹlẹgbẹ rẹ bi ina ti fẹ pa wọn lẹnu mọ, “nipa oore ọfẹ Ọlọrun, a yoo tan imọlẹ kan ni England loni, ti mo ni igbagbọ wipe a ki yoo le paku.”

Irugbin otitọ ti Columba ati awọn alabaṣiṣẹpọ rẹ fọn kalẹ ni Scotland koi tii parun tan. Fun ọpọ ọdun lẹyin ti awọn ijọ ni England tẹriba fun aṣẹ Romu, awọn ti Scotland ṣi ni ominira wọn. Ṣugbọn ni ọrundun kejila, a fi ẹsin popu lọlẹ nibẹ, ko si si ilu miran ti o ti jẹ abaṣẹ wàá bi ti ibẹ. Ko si ibi ti okunkun rẹ ti tun gbilẹ. Sibẹ awọn itansan imọlẹ n wa lati tan si okunkun, wọn si n funni ni ileri ọjọ ti n yọ. Awọn Lollards wa lati England pẹlu Bibeli ati awọn ikọni Wycliffe, wọn ṣiṣẹ pupọ lati pa imọ iyinrere mọ, ko si akoko ti ko ni awọn ẹlẹri ati ajẹriku tirẹ.

Nigba ti iṣẹ Atunṣe nla bẹrẹ, awọn iwe Luther ti jade, lẹyin eyi, Majẹmu Tuntun ti Tyndale ni ede England. Awọn oloye ijọ ko mọ, awọn iranṣẹ wọnyi rọra la awọn oke ati afonifoji kọja laisi ariwo, wọn n tun imọlẹ otitọ ti o ti fẹrẹ paku tan ni Scotland tan, wọn si n ṣe atunṣe si iṣẹ ti ifiyajẹni Romu ṣe fun irinwo ọdun.

Ẹjẹ awọn ajẹriku fun ẹgbẹ naa ni okun tuntun. Awọn adari ijọ padi taji si ewu ti o n wu iṣẹ wọn lojiji, wọn si sun diẹ lara awọn ti wọn níyì, ti wọn si lọla julọ ninu awọn ọmọ ilẹ Scotland níná. Wọn gbe pẹpẹ iwaasu dide, nibi ti a ti n gbọ ọrọ awọn ajẹri ti n ku lọ wọnyi kaakiri gbogbo ilẹ naa, o si n mu inu awọn eniyan dun pẹlu erongba ainipẹkun lati ja ide igbekun Romu.

Hamilton ati Wishart, iwa wọn dara gẹgẹ bi a ti bi wọn lati ile rere, pẹlu ọpọ awọn ọmọ ẹyin wọn fi ẹmi wọn lelẹ ninu ina. Ṣugbọn ẹnikan jade wa lati ibi ti a ti dana sun Wishart, ẹni ti ina ko le pa lẹnu mọ, ẹni ti yoo ṣe akọlu si ẹsin popu patapata ni Scotland labẹ itọsọna Ọlọrun.

John Knox yipada kuro ninu aṣa ati mimọ Ọlọrun pẹlu adura ati asaro ti ijọ lati jẹ ninu awọn otitọ ọrọ Ọlọrun; ikọni Wishart tun fun ipinu rẹ lokun lati fi ijọ Romu silẹ, ati lati darapọ mọ awọn Alatunṣe ti a n ṣe inunibini si.

Awọn ọrẹ rẹ rọ ọ lati ṣe iṣẹ oniwaasu, ko fe gba ojuṣe yii nitori ibẹru, lẹyin ọjọ diẹ ti o se ara rẹ mọle, ti o si ṣe asaro kikankikan ninu ọkan ara rẹ ni o to gba. Ṣugbọn lẹyin igba ti o gba ipo yii, o tẹsiwaju pẹlu ipinu ti a ko le yipada ati igboya ti ko yẹ ni gbogbo igba ti o wa laaye. Alatunṣe ọlọkan tootọ yii ko bẹru oju eniyan. Ina ajẹriku ti n jo layika rẹ tubọ n jẹ ki itara rẹ o pọ si ni. Pẹlu aake onroro ti n jo belebele lori rẹ, o duro gbọin, o n tako ẹsin ibọrisa lọtunlosi ati lati le bi i wo.

Nigba ti o fi ojukoju pẹlu ọbabinrin Scotland, niwaju ẹni ti itara ọpọlọpọ awọn adari Protestant ti n dinku, John Knox jẹri si otitọ laimikan. A ko le fi oju rere yi ọkan rẹ pada; ko si ṣojo niwaju ihalẹ.

Ọbabinrin naa fi ẹsun ẹkọ odi kan an. O kọ awọn eniyan lati gba ẹsin ti ilu ko fi ọwọ si, o wa sọ wipe, o ru ofin Ọlọrun ti o ni ki awọn ọmọ ilu o ṣe igbọran si awọn ijoye wọn. Knox dahun pẹlu iduroṣinṣin wipe:

"Niwọn igba ti ẹsin tootọ ki i ti i gba agbara tabi aṣẹ rẹ lati ọdọ awọn ijoye aye, bikoṣe lati ọdọ Ọlọrun ayeraye nikanṣoṣo, bẹẹ gẹgẹ ni awọn ọmọ ilu wọn ko gbọdọ ṣe ẹsin wọn gẹgẹ bi ifẹ awọn ijoye wọn. Nitori ni ọpọ igba ni awọn ijoye maa n jẹ òpè julọ ninu gbogbo awọn eniyan nipa ẹsin Ọlọrun tootọ. . . . Bi gbogbo iru ọmọ Abrahamu ba n ṣe ẹsin Farao, ẹni ti wọn jẹ ọmọ ilu rẹ fun igba pipẹ, mo bẹ ọ arabinrin, iru ẹsin wo ni iba wa ninu aye? Tabi bi gbogbo eniyan ba n ṣe ẹsin awọn ọba Romu ni akoko awọn apostoli, iru ẹsin wo ni iba wa ni ori ilẹ aye? . . . Nitori naa arabinrin, o le ri wipe ko jẹ dandan ki awọn ọmọ ilu o ṣe ẹsin awọn ijoye wọn, bi o tilẹ jẹ wipe a paṣẹ wipe o yẹ ki wọn ṣe igbọran si wọn."

Maria dahun wipe: "Ẹyin n tumọ Iwe Mimọ ni ọna kan, awọn [awọn olukọ Katoliki ti Romu] n tumọ rẹ ni ọna miran; tani ki emi o gbagbọ, ati tani yoo jẹ adajọ?"

Alatunṣe naa dahun wipe, "Iwọ gba Ọlọrun, ti n sọrọ kedere lati inu ọrọ Rẹ gbọ; ati pe o ko gbọdọ gba ohunkohun ti o ba yatọ si ohun ti ọrọ naa ba fi kọni gbọ. Ọrọ Ọlọrun han kedere ninu ara rẹ; bi ohunkohun ba ṣokunkun, Ẹmi Mimọ ti ki i tako ara Rẹ yoo ṣe alaye rẹ yekeyeke ni ibo miran, ti ko fi ni si iyemeji mọ ayafi fun ẹnikẹni ti o ba mọọmọ jẹ alaimọkan."

Iru awọn otitọ bawọnyi ni Alatunṣe ti ko bẹru naa sọ ni eti ọbabinrin pẹlu ẹmi rẹ ninu ewu. Pẹlu iru igboya kan naa, o di ero rẹ mu ṣinṣin, o n gbadura, o si n ja ogun Oluwa titi ti Scotland fi bọ kuro lọwọ ẹsin popu.

Bi a ti fi ẹsin Protestant mulẹ ni England gẹgẹ bi ẹsin orilẹ ede din inunibini ku, ṣugbọn ko da duro patapata. Nigba ti wọn kọ ọpọlọpọ awọn ikọni Romu silẹ, wọn si tun di ọpọlọpọ awọn aṣa rẹ mu. Wọn kọ aṣẹ popu silẹ, ṣugbọn wọn fi ọba jẹ olori ijọ dipo rẹ. Wọn yapa pupọpupọ kuro ninu iwa mimọ ati ailabawọn iyinrere ninu isin wọn. Wọn koi ti i ni oye ẹkọ nla ominira ti ẹsin. Bi o tilẹ jẹ wipe awọn alaṣẹ ti wọn jẹ Protestant ki i saba maa n lo awọn iwa onroro ti Romu maa n lo lati tako ẹkọ odi, sibẹ a ko bọwọ fun ẹtọ olukuluku lati jọsin Ọlọrun gẹgẹ bi ẹri ọkan rẹ ti sọ ọ. Gbogbo eniyan ni a fẹ ki o gba awọn ikọni ki wọn si tẹle ilana ijọsin ti ijọ ilu ba gbe kalẹ. Awọn ti ko gbà a jiya inunibini lọna pupọ tabi kekere fun ọpọ ọdun.

Ni ọrundun kẹtadinlogun, ọpọ alufa ni a yọ kuro ninu ipo wọn. A fi ofin de awọn eniyan, bi wọn ko ba fẹ san owo itanran nla, tabi ki wọn lọ si ọgba ẹwọn, tabi ki a lé wọn kuro ninu ilu, lati maṣe kopa ninu

ipade ẹsin kankan ayafi eyi ti ijọ ba fi ọwọ si. O pan dandan fun awọn ti wọn jẹ olootọ ti wọn ko le ṣe e lati ma jọsin Ọlọrun lati pade ni ibi hiha ati ibi ti o farasin lati maa jọsin, ati ni igba miran ninu igbo ni aṣalẹ. Awọn ọmọ Oluwa ti a fọnka ti a n ṣe inunibini si n pejọ pọ sinu igbo ti o n daabo bo wọn, tẹmpili ti Ọlọrun funra Rẹ kọ, lati tu ọkan wọn sita ninu adura ati iyin. Ṣugbọn pẹlu gbogbo iṣọra wọn, ọpọlọpọ ni wọn jiya nitori igbagbọ wọn. Ọgba ẹwọn kun akunfaya. A le awọn miran lọ si ilẹ ajeji. Sibẹ Ọlọrun wa pẹlu awọn eniyan Rẹ, inunibini ko si le ṣiṣẹ lati pa ijẹri wọn lẹnu mọ. Ọpọlọpọ ni a le lọ kọja okun lọ si ilẹ America, ti wọn si fi ipilẹ ominira ẹsin ati ijọba lelẹ nibi, eyi ti o jẹ agbara ati ogo orilẹ ede yii.

O tun ṣẹlẹ gẹgẹ bi o ti ṣẹlẹ ni akoko awọn apostoli, inunibini ṣiṣẹ lati jẹ itẹsiwaju fun iyinrere. Ninu ile ẹwọn ẹlẹgbin ti a ko awọn ọdaran ati awọn oniwabuburu si, John Bunyan n gbe ni ayika ọrun; nibẹ ni o ti kọ iwe apejuwe agbayanu rẹ ti o sọ nipa arinrin ajo kan ti o n kọja lọ lati ilẹ iparun lọ si ilu mimọ. Fun bi igba ọdun ohùn naa lati inu ọgba ẹwọn Bedford si n ba ọkan awọn eniyan sọrọ pẹlu agbara ti n mi ni lọkan. Pilgrim's Progress (Itẹsiwaju Arinrinajo) ati Grace Abounding to the Chief of Sinners (Oore ọfẹ ti o pọ Yanturu fun Ọga awọn Ẹlẹṣẹ) ti Bunyan kọ ti dari ọpọlọpọ ẹṣẹ si ọna iye.

Baxter, Flavel, Alleine, ati awọn eniyan miran ti wọn ni ẹbun, ti wọn mọwe, ti wọn tun ni iriri ti o jinlẹ ninu igbagbọ Kristẹni dide lati ṣe igbeja akọni fun igbagbọ ti a fun awọn eniyan mimọ lẹẹkan ṣoṣo. Iṣẹ ti awọn eniyan wọnyi ṣe, awọn ti awọn alaṣẹ aye fi ofin de, ti wọn tun tako, ko le parun laelae. Fountain of Life (Orisun Iye) ati Method of Grace (Ilana Oore Ọfẹ) ti Flavel kọ ti kọ ọpọlọpọ awọn eniyan bi wọn ti ṣe le pa ọkan wọn mọ si ọdọ Kristi. Reformed Pastor (Alufa ti a Fọ Mọ) ti Baxter kọ ti jẹ ibukun fun ọpọlọpọ ti wọn fẹ isọji ninu iṣẹ Ọlọrun, ati Saints' Everlasting Rest (Isinmi Ainipẹkun fun Awọn Eniyan Mimọ) rẹ ti ṣiṣẹ lati dari awọn eniyan si "isinmi" ti o kù fun awọn eniyan Ọlọrun.

Ọgọrun ọdun lẹyin eyi, ni akoko okunkun nla, Whitefield ati awọn Wesley fi ara han gẹgẹ bi atan-imọlẹ fun Ọlọrun. Labẹ akoso ijọ ilu, awọn eniyan England rẹwẹsi ninu ẹsin ti o fi jẹ wipe a nira pupọ lati da a mọ yatọ si ẹsin ibọriṣa. Ẹsin ibilẹ ni ohun ti o n wu awọn alufa lati kọ, o si wọpọ ninu awọn ohun ti wọn gbagbọ nipa Ọlọrun. Awọn eniyan pataki ninu ilu kẹgan ẹmi ifọkansin, nitori wọn ri ara wọn bi ẹni ti o ga ju erokero ẹsin rẹ lọ. A fi awọn eniyan lasan ti wọn ku ninu ilu, ti wọn jẹ ope paraku silẹ fun iwa ipa, ti ijọ ko si ni igboya tabi igbagbọ lati ṣe atilẹyin fun iṣẹ otitọ ti o ti ṣubu.

Ikọni nla ti idalare nipa igbagbọ ti Luther fi kọni yekeyeke ni a ti fẹrẹ gbagbe tan; ilana ẹsin Romu ti gbigbẹkẹle iṣẹ rere fun igbala

si ti rọpo rẹ. Whitefield ati awọn Wesley, jẹ ọmọ ijọ ilu, ṣugbọn wọn fi tọkantọkan wa ojurere Ọlọrun, a si ti kọ wọn wipe wọn le ri nipa igbesi aye mimọ ati ṣiṣe awọn ojuṣe ẹsin.

Nigba ti ara Charles Wesley ko ya nigba kan, ti a si ro wipe yoo ku, a beere lọwọ rẹ ohun ti ireti iye ainipẹkun rẹ duro le lori. Idahun rẹ ni pe: "Mo ti fi gbogbo agbara mi sin Ọlọrun." Nigba ti o dabi ẹnipe idahun rẹ ko tẹ awọn ọrẹ rẹ ti wọn beere ibeere yii lọrun, Wesley ro wipe: "Kini! ṣe awọn akitiyan mi ko to ipilẹ fun ireti ni? Ṣe yoo wa fi awọn akitiyan mi dun mi ni? Mi o ni ohun miran lati gbẹkẹle?" Iru okunkun dudu yii ni o ṣubu si ori ijọ, ti o mu iwẹnumọ ẹṣẹ pamọ, ti o fi ogo Kristi dun Un, ti o si n yi ọkan awọn eniyan kuro ninu ireti kan ṣoṣo fun igbala—ẹjẹ Olurapada ti a kan mọ agbelebu.

A dari Wesley ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ lati ri wipe inu ọkan ni ẹsin tootọ wa, ati wipe ofin Ọlọrun tàn de inu ero ati iṣe pẹlu. Pẹlu igbagbọ wipe o jẹ dandan ki ọkan o jẹ mimọ ati wipe o yẹ ki iwa o tọna, wọn fi tọkantọkan bẹrẹ igbesi aye tuntun. Pẹlu iṣẹ agbara ati adura wọn ṣe akitiyan lati bori iwa ibi ti o wa ninu ọkan. Wọn gbe igbesi aye iṣẹra-ẹni, ifẹ, ati irẹlẹ, wọn n fi okun nla ṣe akiyesi ati aṣerege ohun gbogbo ti wọn ro wipe yoo ran wọn lọwọ lati ri ohun ti wọn nifẹsi julọ—iwa mimọ naa ti yoo jẹ ki wọn ri oju rere Ọlọrun. Ṣugbọn wọn ko ri ohun ti wọn n wa. Pabo ni gbogbo akitiyan wọn lati yọ ara wọn kuro ninu idalẹbi ẹṣẹ tabi lati ja ara wọn gba kuro lọwọ agbara rẹ. Iru ijakadi yii kan naa ni Luther ni iriri rẹ ni yara rẹ ni Erfurt. Iru ibeere kan naa ni o n damu ọkan rẹ—"Bawo ni eniyan ṣe le jẹ olododo niwaju Ọlọrun?" Jobu 9:2.

A yoo tun ina otitọ ti o ti fẹrẹ ku tan ni ori pẹpẹ ẹsin Protestant tan lati ara ina atijọ ti a mu wa lati ọdun gbọọrọ nipasẹ awọn Kristẹni Bohemia. Lẹyin iṣẹ Atunṣe, awọn ọmọ ogun Romu pa ẹsin Protestant rẹ ni Bohemia. O di dandan fun gbogbo awọn ti wọn kọ lati kọ otitọ silẹ lati salọ. Awọn miran ri aabo ni Saxony, wọn si pa igbagbọ atijọ mọ nibẹ. Lati ọdọ awọn arọmọdọmọ Kristẹni wọnyi ni imọlẹ ti wa si ọdọ Wesley ati awọn akẹgbẹ rẹ.

A ran John ati Charles Wesley lọ gẹgẹ bi ajiyinrere ni ilẹ Amerika lẹyin ti a ti gbe ọwọ le wọn lori ninu iṣẹ iwaasu. Ẹgbẹ awọn Moravia kan wa ninu ọkọ oju omi ti wọn wa. Wọn koju ìjì líle ni oju ọna, John Wesley fi oju koju pẹlu iku, o si ri wipe ohun ko ni idaniloju alaafia pẹlu Ọlọrun. Awọn ara Germany ni idakeji fi idakẹrọrọ ati igbẹkẹle ti o ṣajeji si han.

O sọ wipe, "O ti pẹ ti mo ti n wo iwa atọkanwa wọn. Gbogbo igba ni wọn n jẹri si ẹmi irẹlẹ wọn, nipa ṣiṣe iṣẹ pẹpẹẹpẹ fun awọn ero inu ọkọ ti eyikeyi ninu awọn ara England ko le ṣe; eyi ti wọn n fẹ lati ṣe laigba owo, wọn n sọ wipe o dara fun ọkan igberaga wọn, ati

Olugbala wọn ti O jẹ onifẹ ti ṣe ju iyẹn lọ fun wọn. Ojoojumọ si ni wọn maa n ri anfani lati fi iwa tutu han, eyi ti iwa ipa kan ko le yẹ. Bi a ba ti wọn, lu wọn, tabi ju wọn si ẹgbẹ kan, wọn a dide, wọn a si gba ibomiran lọ; ko si aroye kan ni ẹnu wọn. Anfani wa wa nisinsinyi lati fihan boya a ti gbà wọn kuro lọwọ ẹmi ibẹru gẹgẹ bi a ti gba wọn kuro lọwọ ẹmi igberaga, ibinu ati igbẹsan. Ni akoko ti wọn n kọ orin ti wọn fi bẹrẹ isin wọn, okun ru soke, o si fọ ìgbòkun ọkọ ti o ṣe pataki julọ si wẹwẹ, omi bo inu ọkọ, o si kun bebe ọkọ ti o fi dabi ẹnipe omi ti gbe wọn mi. Awọn ara England bẹrẹ si ni i pariwo. Awọn ara Germany n fi pẹlẹkutu kọrin lọ. Nigba ti o ya, mo beere lọwọ ọkan lara wọn wipe 'Ṣe ẹru ko ba yin ni?' O dahun wipe, 'Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun, rara.' O fi irẹlẹ dahun wipe, 'Rara; awọn obinrin ati awọn ọmọde wa ko bẹru lati ku'"

Nigba ti wọn de Savannah, Wesley gbe pẹlu awọn ara Moravia fun igba diẹ, iwa Kristẹni wọn si fi ọwọ ba a lọkan pupọpupọ. Nigba ti o n fi ilana ẹsin ijọ England ti ko ni ẹmi we ọkan lara isin wọn, o kọwe wipe: "Ailabula ati ọwọ gbogbo rẹ fẹrẹ jẹ ki n gbagbe ẹẹdẹgbẹsan (1700) ọdun ti o wa ni aarin wọn, mo ronu wipe mo wa ninu awujọ ti ko ti si aṣa tabi ijọba; ṣugbọn ti Ọlu apàtíbàbà, tabi Peteru apẹja dari eto naa; sibẹ pẹlu ifihan Ẹmi ati agbara."

Nigba ti o pada si England, labẹ itọsọna oniwaasu ara Moravia, Wesley ni oye kikun nipa igbagbọ inu Bibeli. O ri wipe oun nilati kọ gbogbo igbẹkẹle oun ninu iṣẹ ọwọ ara oun fun igbala silẹ, oun si nilati gbẹkẹle "Ọdọ Aguntan Ọlọrun ti o ko ẹṣẹ araye lọ" patapata. Ninu ipade ẹgbẹ awọn ara Moravia kan ni London, a ka gbolohun kan lati inu iwe Luther, ti o ṣe alaye iṣẹ Ẹmi Ọlọrun ninu ọkan onigbagbọ. Bi Wesley ti tẹti silẹ, igbagbọ tan ninu ọkan rẹ. O sọ wipe, "Mo ri ti ọkan mi gbona ni ọna ti o ṣajeji." "Mo ni imọlara wipe mo gbẹkẹle Kristi, Kristi nikan ṣoṣo fun igbala: a fun mi ni idaniloju wipe O ti ko awọn ẹṣẹ mi ani temi, o si ti gbami la kuro ni ọwọ ofin ẹṣẹ ati iku."

Ni gbogbo ọdun gbọọrọ ti o fi n ṣe wahala ti n kaarẹ bani, ti ko si fun ni itunu—awọn ọdun iṣẹra kikoro, itiju ati irẹra-ẹni silẹ—Wesley fi tọkantọkan rọ mọ ero rẹ kan ṣoṣo lati ri Ọlọrun. Ni akoko yii, o ri I, o si ri oore ọfẹ ti o n ṣe wahala lati ni nipa awẹ ati adura, nipa ṣiṣe itọrẹ aanu ati iṣẹra ẹni, wipe ẹbun ni, "laisi owo tabi idiyele."

Lọgan ti a fi ẹsẹ rẹ mulẹ ninu Kristi, ọkan rẹ gbona pẹlu ifẹ lati tan imọ iyinrere ologo ti oore ọfẹ Ọlọrun lọfẹ kalẹ si ibi gbogbo. O sọ wipe, "Mo ri gbogbo aye gẹgẹ bi agbegbe mi; nibikibi ti mo ba wa ninu rẹ, mo ri wipe o yẹ o tọ, ojuṣe mi si ni lati sọ iroyin ayọ igbala fun gbogbo ẹni ti o ba fẹ lati gbọ."

O tẹsiwaju ninu igbesi aye ofin toto ati iṣẹra ẹni rẹ, ṣugbọn nisinsinyii, ki i ṣe idi, bikoṣe ayọrisi igbagbọ; ki i ṣe gbongbo, bikoṣe eso iwa mimọ. Oore ọfẹ Ọlọrun ninu Kristi ni ipilẹ ireti Kristẹni, oore ọfẹ yii yoo si fi ara han ninu igbọran. Wesley fi igbesi aye rẹ jin fun iwaasu awọn otitọ nla ti o ti gba—idalare nipa igbagbọ ninu ẹjẹ iwẹnumọ Kristi, ati agbara iyipada Ẹmi Mimọ ninu ọkan, ti n mu eso wa ninu igbesi aye ti o ba apẹẹrẹ Kristi mu.

A ti pese Whitefield ati awọn Wesley silẹ fun iṣẹ wọn pẹlu imọlara inira ọlọjọ pipẹ nipa bi wọn ti sọnu; ki wọn baa le fi ara da ijiya gẹgẹ bi ọmọ ogun rere fun Kristi. Wọn ti fi ara da inira nla ti ẹgan, ifini sẹsin, ati inunibini, ninu ile ẹkọ giga, ati bi wọn ti fẹ wọ inu iṣẹ iwaasu. Awọn ati awọn perete miran ti wọn n tẹle wọn ni awọn ẹlẹgbẹ wọn ti ko mọ Ọlọrun n fi ẹgan pe ni awọn Methodist—orukọ ọkan ninu awọn ijọ ti wọn tobi julọ ni ilẹ Amerika ati England ti a wa n ri gẹgẹ bi eyi ti o ni iyin.

Gẹgẹ bi ọmọ ijọ England, wọn n fi gbogbo agbara tẹle ilana isin rẹ, ṣugbọn Oluwa ti fi ipele ti o ga ju eyi lọ han wọn ninu ọrọ Rẹ. Ẹmi Mimọ rọ wọn lati waasu Kristi, Ẹni ti a kan mọ agbelebu. Agbara Ẹni Giga julọ wa pẹlu iṣẹ wọn. Ọpọlọpọ ni wọn gbagbọ ti wọn si yipada ni tootọ. O di dandan ki a daabo bo awọn aguntan wọnyi kuro ni ọwọ awọn ikooko ti n dọdẹ kiri. Wesley ko ni erongba lati da ijọ tuntun silẹ, ṣugbọn o ko wọn jọ si abẹ ohun ti o pe ni Methodist Connection (Ifarakora Eleto).

Atako ti awọn oniwaasu wọnyi ba pade ninu ijọ ilu yanilẹnu, o si lagbara; sibẹ Ọlọrun, ninu ọgbọn Rẹ jẹ ki awọn iṣẹlẹ o mu ki atunṣe o bẹrẹ ninu ijọ naa funra rẹ. Bi o ba jẹ wipe lati ita nikan ni o ti wa ni, ki i ba ti gbilẹ de ibi ti a ti nilo rẹ. Ṣugbọn niwọn igba ti awọn ti wọn n waasu isọji jẹ awọn ọmọ ijọ lasan, ti wọn si n ṣiṣẹ laarin ijọ nibikibi ti wọn ba ti ni anfani, otitọ naa ri aaye wọ inu ibi ti à bá ti ti ilẹkun mọ bi ki i ba ṣe bẹẹ. Diẹ lara awọn alufa ijọ taji kuro ni oju orun wọn, wọn si fi itara waasu ninu agbegbe wọn. Awọn ijọ ti aṣa ti sọ di oku ji dide wa si iye.

Ni akoko Wesley, gẹgẹ bi o ti ṣẹlẹ ninu gbogbo itan ijọ, awọn eniyan ti wọn ni orișiriși ẹbun ṣe iṣẹ ti a fifun wọn. Wọn ko fi ohùn ṣọkan lori gbogbo ikọni, ṣugbọn Ẹmi Ọlọrun dari gbogbo wọn, wọn si parapọ ninu erongba kan ṣoṣo lati jere ọkan fun Kristi. Awọn iyatọ ti o wa laarin awọn Wesley ati Whitefield fẹ fa iyapa ni aarin kan; ṣugbọn bi wọn ti kọ nipa ọkan tutu ni ile ẹkọ Kristi, ifarada ati ifẹ ṣe ibalaja laarin wọn. Wọn ko ni akoko lati ṣe ariyanjiyan, nigba ti eke ati ẹṣẹ n gbilẹ ni ibi gbogbo, ti awọn ẹlẹṣẹ si n ṣegbe.

Awọn iranṣẹ Ọlọrun rin ni ọna hiha. Awọn alagbara ati ọmọwe lo agbara wọn lati tako wọn. Lẹyin igba diẹ, ọpọ awọn alufa mọọmọ

ṣe atako si wọn, a si ti ilẹkun awọn ile ijọsin mọ igbagbọ mimọ ati awọn ti wọn n waasu rẹ. Iwa awọn alufa, ni titako wọn lati ori pẹpẹ iwaasu ru okunkun, aimọkan ati ẹṣẹ soke. Lati igba de igba ni John Wesley bọ kuro lọwọ iku nipasẹ iṣẹ iyanu aanu Ọlọrun. Nigba ti ibinu awọn janduku ru si, ti o da bi ẹnipe ko si ọna abayọ, angẹli kan ni irisi eniyan wa si ẹgbẹ rẹ, awọn janduku naa ṣubu sẹyin, iranṣẹ Kristi si kuro ninu ewu ni alaafia.

Wesley sọ nipa igbasilẹ rẹ kuro lọwọ awọn janduku ti n binu ninu ọkan ninu iru awọn iṣẹlẹ wọnyi pe: "Ọpọlọpọ sa ipa lati ju mi silẹ nigba ti a n sọkalẹ lori oke kan ni oju ọna ti n yọ lọ si inu ilu; wọn ri wipe bi mo ba le balẹ, mi o nile dide mọ lae. Ṣugbọn mi o ṣubu rara, ani mi o yẹsẹ, titi ti mo fi kuro ni ọwọ wọn patapata. . . . Bi o tilẹ jẹ wipe ọpọ ni wọn fẹ di aṣọ tabi ìborùn mi mu, lati le fa mi silẹ, ṣugbọn wọn ko ri mu rara: ọkan ṣoṣo ni o di bebe aṣọ ileke mi mu, ti o si jabọ kuro ni ọwọ rẹ kankan; a ya abala keji ti owo wa ninu apo rẹ si meji. . . . Ọkunrin kan ti o ṣigbọnlẹ lẹyin mi fi igi nla kan lu mi fun igba diẹ; eyi ti o jẹ wipe bi o ba ba mi lẹyin ori, ko ni nilo lati ṣe wahala kankan mọ. Ṣugbọn gbogbo igba ni ìkúùkù naa n bọ si ibomiran, mi o mọ bi o ṣe ṣẹlẹ; nitori pe mi o le mi si ọtun tabi osi. . . . Omiran sare jade wa laarin ero, o gbe ọwọ rẹ soke lati lumi, ṣugbọn lojiji ọwọ rẹ jabọ, o wa fi ọwọ pa mi lori, o wipe, 'Irun rẹ ti fẹlẹ to!' . . . Awọn akọkọ ti ọkan wọn yipada jẹ awọn akikanju ninu ilu naa, awọn adari awọn ọmọ ita, ti ọkan ninu wọn ti gba ẹbun fun jija ni ọgba beari. . . .

"Ṣugbọn diẹdiẹ ni Ọlọrun n pese wa silẹ fun ifẹ Rẹ! Ni ọdun meji sẹyin, biriki kan fo ejika mi kọja. Ọdun kan lẹyin eyi, okuta kan bami ni aarin oju. Ni osu to kọja, ikuuku kan ba mi, ni aṣalẹ yii meji, ọkan ṣaaju ki a to wọ inu ilu yii, ekeji lẹyin ti a jade; ṣugbọn awọn mejeeji ko jasi ohun kankan: bi o tilẹ jẹ wipe ẹnikan fi gbogbo agbara rẹ gba mi laya, ti omiran si gba mi lẹnu pẹlu gbogbo agbara ti o fi jẹ wipe ẹjẹ n jade ni ẹnu mi loju ẹsẹ, ko si eyi ti o ro mi lara ninu mejeeji, o dabi ẹnipe wọn fi koriko gbigbẹ kàn mi lasan ni."

Awọn Methodist ti akoko iṣaaju naa—awọn eniyan pẹlu awọn oniwaasu—fi ara da ifinisẹsin, ati inunibini lati ọdọ awọn ọmọ ijọ ati awọn ti ko lẹsin ti ara wọn gbona nitori bi a ti ṣe afihan wọn lọna ti ko tọ. A pe wọn lejọ si ile ẹjọ—ile idajọ ni orukọ lasan—nitori idajọ ṣọwọn ni akoko naa. Ni ọpọ igba wọn jiya ipa lọwọ awọn oninunibini wọn. Awọn ọmọ ita n lọ lati ile de ile, wọn n ba dukia ati ohun ẹsọ ile jẹ, ti wọn si n ji ohunkohun ti wọn ba fẹ, wọn a fiya jẹ awọn ọkunrin, ati obinrin ati ọmọde lọna ika. Ni igba miran, wọn a gbe ikede sita ti wọn a pe gbogbo awọn ti wọn ba fẹ lati fọ oju ferese ati lati ji ẹru ko ni ile awọn Methodist lati pade ni ibi kan ati ni akoko kan. A si n jẹ

ki titẹ ofin eniyan ati ti Ọlọrun loju yii maa lọ laisi ibawi. A fi eto gbé inunibini kalẹ si awọn ti o jẹ wipe ẹṣẹ kan ṣoṣo ti wọn ṣẹ ko ju wipe wọn n wa lati yi ẹsẹ awọn ẹlẹṣẹ kuro ni ọna iparun pada si oju ọna iwa mimọ lọ.

Nigba ti John Wesley n sọrọ nipa awọn ẹsun ti wọn fi kan an ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ, o sọ wipe: "Awọn kan sọ wipe irọ ni awọn ikọni awọn eniyan wọnyi, ati wipe ko tọna, ariwo lasan si ni; wipe wọn jẹ ọtun, a koi si ti i gbọ nipa wọn ri; wipe ikọni awọn Quaker ni, irokuro nipa ẹsin ni, ẹsin popu ni. Gbogbo irọ wọnyi ni a ti gé ti gbongbo ti gbongbo, nigba ti a ti fihan daradara wipe gbogbo ẹka ikọni yii jẹ ikọni ti o han kedere lati inu Iwe Mimọ ti ijọ wa ṣe itumọ rẹ. Nitori naa, a ko le sọ wipe irọ ni wọn tabi wipe wọn jẹ aṣiṣe, bi Iwe Mimọ ba le jẹ otitọ." "Awọn miran sọ wipe, 'Ikọni wọn ti nira ju; wọn ti jẹ ki ọna ọrun o ṣe tooro ju.' Eyi si ni atako gan an ni pato, (nitori òhun nikanṣoṣo ni a ri fun igba diẹ,) ohun si ni o wa ni idi ọpọlọpọ omiran, ti wọn fi ara han ni orişirişi ọna. Ṣugbọn ṣe wọn jẹ ki ọna si ọrun o tooro ju bi Oluwa wa ati awọn apostoli Rẹ ti ṣe e lọ ni? Ṣe ikọni wọn nira ju ti Bibeli lọ ni? Ẹ wo awọn ẹsẹ diẹ wọnyi: 'Ki iwọ ki o fẹran Oluwa Ọlọrun rẹ pẹlu gbogbo ọkan rẹ, ati pẹlu gbogbo ẹmi rẹ, ati pẹlu gbogbo aya rẹ, ati pẹlu gbogbo agbara rẹ.' 'Nitori gbogbo oro were ti eniyan ba sọ ni yoo jiyin rẹ ni ọjọ idajọ.' 'Bi ẹyin ba jẹ, tabi bi ẹyin ba mu, tabi ohunkohun ti ẹyin ba ṣe, ẹ ṣe wọn si ogo Ọlọrun.'

"Bi ikọni wọn ba nira ju eyi lọ, awọn ni a maa da lẹbi; ṣugbọn ẹyin mọ ninu ọkan yin wipe ko ri bẹẹ. Tani o si le pa ọrọ Ọlọrun mọ ṣugbọn ti o yọ eyi ti o kere julọ kuro ninu rẹ ti ko ni ba ọrọ Ọlọrun jẹ? Sẹ iriju awọn ohun ijinlẹ Ọlọrun şi le jẹ olootọ bi o ba yi eyikeyi ninu ọrọ mimọ pada? Rara! Ko le mu ohunkohun kuro, ko le sẹ ohunkohun rọ; o nilo lati sọ fun gbogbo eniyan, 'Mi o le fa Iwe Mimọ sisalẹ lati ba ifẹ yin mu. Ẹ nilati wa si ọdọ rẹ ni, tabi ki ẹ di ẹni iparun laelae.' Eyi ni idi kan ṣoṣo ti gbogbo eniyan fi n kigbe nipa 'ainifẹ awọn eniyan wọnyi.' Alainifẹ, ṣe lootọ ni? Ni ọna wo? Ṣe wọn ko fun ẹni ti ebi n pa ni ounjẹ ni tabi wọn ko fi aṣọ wọ ẹni ti o wa ni ihoho? Rara; ki i ṣe iyẹn ni: wọn ko baku ninu eyi: ṣugbọn wọn jẹ alainifẹ ninu ṣişe idajọ! wọn ro wipe a ko le gba ẹnikẹni la ayafi awọn ti n rin ni ọna wọn.'"

Ifasẹyin ti ẹmi ti o fi ara han ninu ijọ England ni kete ṣaaju akoko Wesley waye, ni ọna ti o pọ julọ, nitori ikọni wipe ko si ofin mọ. Ọpọlọpọ ni wọn sọ wipe Kristi ti pa ofin rẹ ati wipe awọn Kristẹni ko ni ojuṣe lati paamọ mọ; wipe a ti yọ awọn onigbagbọ kuro ninu "igbekun işẹ rere." Bi o tilẹ jẹ wipe awọn miran gba wipe ofin naa wa titi lae, wọn sọ wipe ko ṣe pataki ki awọn alufa wọn o kọ awọn

eniyan lati ṣe igbọran si awọn ilana rẹ, nitori pe awọn ti Ọlọrun ti yan si igbala a, “pẹlu agbara oore ọfẹ Ọlọrun ti a ko le tako, ni agbara lati wu iwa ifọkansin ati iwa ti o dara,” nigba ti awọn ti a ti yan fun iparun ayeraye “ko ni agbara lati pa ofin Ọlọrun mọ.”

Awọn miran gbagbọ wipe “awọn ti a ti yan ko le ṣubu kuro ninu oore ọfẹ tabi padanu oju rere Ọlọrun,” wọn tun ṣe akotan ti o buru ju eyi lọ wipe “iwa buburu ti wọn ba wu ki i ṣe ẹṣẹ, bẹẹ si ni a ko le ri bi ẹnipe wọn tako ofin Ọlọrun, nitori naa wọn ko nilo lati ṣe ijẹwọ ẹṣẹ tabi lati kọ wọn silẹ nipa ironupiwada.” Nitori naa, wọn sọ wipe ọkan lara ẹṣẹ ti o ba buru julọ, “ti gbogbo aye ka si riru ofin Ọlọrun, ki i ṣe ẹṣẹ ni oju Ọlọrun,” bi o ba jẹ wipe ọkan lara awọn ayanfẹ ni o da a, “nitori pe o jẹ ọkan lara awọn ohun ti a fi n da awọn ayanfẹ mọ wipe wọn ko le ṣe ohun ti ko tẹ Ọlọrun lọrun tabi ti ofin Rẹ tako.”

Awọn ikọni buburu bawọnyi ni iru awọn ikọni kan naa ti awọn olukọ ati ẹlẹkọ nipa Ọlọrun—wipe ko si ofin kan ti ko ṣe e yipada gẹgẹ bi odiwọn fun ohun ti o tọna, ṣugbọn awujọ funra rẹ ni o maa n ṣe odiwọn fun ohun ti o tọna, eyi ti o maa n yipada nigba gbogbo. Ẹmi nla kan naa ni o n mu gbogbo awọn ero wọnyi wa—ẹni ti o bẹrẹ iṣẹ lati bi ijanu ododo ofin Ọlọrun wo, ani laarin awọn olugbe alailẹṣẹ ni ọrun.

Ikọni nipa aṣẹ Ọlọrun, ti o fi ontẹ lé iwa eniyan ni ọna ti a ko le yipada, ti jẹ ki ọpọlọpọ eniyan o kọ ofin Ọlọrun silẹ. Wesley tako aṣiṣe awọn olukọ ti n kọni wipe ko si ofin yii pẹlu iduroṣinṣin, o si fihan wipe awọn ikọni ti wọn yọri si igbagbọ wipe ko si ofin wọnyi tako Iwe Mimọ. “Oore ọfẹ ti n mu igbala wa ti fi ara han fun gbogbo eniyan.” “Eyi ni o dara ti o si jẹ itẹwọgba ni oju Ọlọrun Olugbala wa; ti o fẹ ki gbogbo eniyan o di ẹni igbala, ki wọn si wa si imọ otitọ. Nitori Ọlọrun kan ṣoṣo ni o wa, ati olubalaja kan laarin Ọlọrun ati eniyan, ọkunrin ni Jesu Kristi; ẹni ti o fi ara Rẹ silẹ fun irapada gbogbo eniyan.” Titu 2:11; I Timoti 2:3-6. A fi Ẹmi Ọlọrun funni lọfẹ lati le ran gbogbo eniyan lọwọ lati gba ilana igbala. Nitori naa, Kristi “Imọlẹ tootọ,” ti tan imọlẹ si gbogbo eniyan ti o wa sinu aye.” Johanu 1:9. Awọn eniyan baku ninu igbala nitori bi wọn ti mọọmọ kọ ẹbun iye silẹ.

Ni idahun si igbagbọ wipe nigba ti Kristi ku, a ti mu Ofin Mẹwa kuro pẹlu ofin ti o ni i ṣe pẹlu ilana ẹsin, Wesley sọ wipe: “Ofin iwuwasi, ti o wa ninu Ofin Mẹwa ti awọn woli ni ki a pamọ, ko mu awọn iyẹn kuro. Ki i ṣe ara ète wiwa Rẹ ni lati mu ọkan ninu eyi kuro. Ofin ti a ko le ge kuro ni eyi, ‘ti o duro gẹgẹ bi ẹlẹri tootọ ni ọrun.’ . . . Eyi wà lati ibẹrẹ aye wa, ‘ki i ṣe ori walaa okuta ni a kọ si’ bikoṣe ọkan awọn ọmọ eniyan, nigba ti wọn wa lati ọwọ Ẹlẹda wọn. Bi o tilẹ jẹ wipe ẹṣẹ ti ba lẹta ti a fi ika Ọlọrun kọ jẹ pupọpupọ, sibẹ a ko le pawọnrẹ patapata,

niwọn igba ti a ba si ni imọ nipa rere ati buburu. Gbogbo abala inu ofin yii ni agbara lori gbogbo eniyan, ni akoko gbogbo, ko da lori akoko tabi ibi ti a wa, tabi ohunkohun ti o le yipada, ṣugbọn lori iwa Ọlọrun, ati iwa eniyan ati ibaṣepọ wọn si ara wọn ti ko le yipada.

" 'Emi ko wa lati pa a run bikoṣe lati mu ṣẹ.' . . . Laisi aniani, itumọ ti o ni nibi (ni iṣọkan pẹlu ohun gbogbo ti o wa ṣaaju ati eyi ti o tẹle), —Mo wa lati fi idi rẹ mulẹ ni kikun, laika gbogbo itumọ eniyan si: Mo wa lati jẹ ki ohunkohun ti o ba ṣokunkun, tabi ti o ba fi ara sin ninu rẹ o han kedere, ki o si yeni yekeyeke: Mo wa lati sọ itumọ gbogbo rẹ ni kikun; lati fihan gígùn ati ìbú gbogbo rẹ, gbogbo ofin ti wọn wa ninu rẹ, ati giga ati jinjin, iwa mimọ rẹ ti ko le yeni tan ati bi o ti jẹ ohun ẹmi to ninu gbogbo ẹka rẹ."

Wesley kede ibaṣepọ pipe ti o wa laarin ofin ati iyinrere. "Nitori naa, ibaṣepọ ti o sunmọ ara wọn pẹkipẹki ti eniyan le rò, wa laarin ofin ati iyinrere. Ni ọna kan, ofin la ọna fún, o si n tọka wa si iyinrere ni gbogbo igba; ni ọna keji, iyinrere n dari wa lati le pa ofin mọ ni pipe si. Bi apẹẹrẹ, ofin fẹ ki a fẹran Ọlọrun, ki a fẹran ẹnikeji wa, ki a jẹ oniwatutu, onirẹlẹ tabi ẹni mimọ. A mọ wipe a kò kun oju oṣuwọn fun gbogbo nnkan wọnyi; sibẹ, 'eyi ko ṣe e ṣe pẹlu eniyan;' ṣugbọn a ri ileri Ọlọrun lati fun wa ni ifẹ naa, lati jẹ ki a jẹ onirẹlẹ, ọlọkan tutu ati ẹni mimọ: a di iyinrere yii mu, iroyin ayọ yii; a ṣe e fun wa gẹgẹ bi igbagbọ wa; 'ododo ofin a si wa di mimuṣe ninu wa,' nipa igbagbọ ti o wa ninu Kristi Jesu. . . .

Wesley sọ wipe, "Awọn ti wọn ga julọ ninu awọn ọta iyinrere Kristi ni awọn ti wọn n ṣe 'idajọ lori ofin' funra rẹ ni gbangba lai pẹ ọrọ sọ, 'ti wọn n sọrọ ibi nipa ofin;' ti wọn n kọ awọn eniyan lati ru (lati fọnka, lati sẹ ẹ rọ, lati yọni kuro ninu ojuṣe rẹ), ki i ṣe ẹyọkan ṣoṣo, boya eyi ti o kere julọ tabi ti o tobi julọ, ṣugbọn gbogbo ofin lapapọ. . . . Ohun ti o yanilẹnu julọ ninu gbogbo awọn ti wọn tẹle itanjẹ lile yii ni wipe, awọn ti wọn ti fi ara wọn jin fun, gbagbọ nitootọ wipe wọn n bu ọla fun Kristi nipa bibi ofin Rẹ ṣubu, ati wipe wọn n gbe iṣẹ Rẹ larugẹ ni nigba ti wọn ba ikọni Rẹ jẹ! Bẹẹni, wọn n bọwọ fun bi Judasi ti ṣe nigba ti o sọ wipe, 'Alaafia Oluwa, ti o si fi ẹnu ko O ni ẹnu.' O jẹ ohun ti o tọna bi o ba sọ fun gbogbo wọn wipe, 'Ṣe pẹlu ifẹnukonu ni iwọ fẹ fi fi Ọmọ eniyan han?' Ko yatọ si wipe a n fihan pẹlu ifẹnukonu bi a ba n sọrọ nipa ẹjẹ Rẹ, ti a si n mu ade Rẹ kuro; ti a tẹnbẹlu eyikeyi ninu ofin Rẹ, labẹ itanjẹ wipe a n jẹ ki iyinrere Rẹ o tẹsiwaju. Bẹẹ si ni ẹnikẹni ko le bọyọ kuro ninu ifẹsunkan yii, bi o ba n waasu igbagbọ ninu ohunkohun boya ni gbangba tabi ni bonkẹlẹ ni ọna ti o le ṣá eyikeyi ninu igbọran tì si ẹgbẹ kan: ti o waasu wipe Kristi ti fagile, tabi sẹ rọ ni ọnakọna, eyi ti o kere julọ ninu awọn ofin Ọlọrun."

Wesley fesi fun awọn ti wọn n sọ wipe “iwaasu iyinrere ni opin ofin” bayi pe: “A ko gba eyi rara. Ko dahun si idi akọkọ fun ofin, eyi ti i ṣe lati fi oye ẹṣẹ ye eniyan, lati ta awọn ti wọn si n sun ni eti bebe ipo oku ji.” Apostoli Pọlu sọ wipe “nipasẹ ofin ni a fi ni imọ ẹṣẹ;” “ati pe igba ti eniyan ba ni oye ẹṣẹ, ni o to le mọ wipe oun nilo ẹjẹ iwẹnumọ ẹṣẹ Kristi nitootọ. . . . Bi Olugbala funra Rẹ ti woye, ‘Awọn ti wọn ko ṣe aisan ko nilo onisegun, bikoṣe awọn ti n ṣe aisan.’ Ko boju mu lati fun ẹni ti ara rẹ ya, tabi ti o ro wipe ara oun ya, ni onisegun. O nilati kọkọ fi ye wọn wipe wọn n ṣe aisan; lalaiṣe bẹẹ, wọn ko ni dupẹ lọwọ rẹ fun gbogbo wahala rẹ. Bẹẹ gẹgẹ ni ko ṣe bojumu lati fi Kristi lọ awọn ti ọkan wọn pé, nitori pe wọn koi ti i ṣe ikaanu fun ẹṣẹ.”

Nitori naa, nigba ti o n waasu iyinrere oore ọfẹ Ọlọrun, Wesley gẹgẹ bi ti Oluwa rẹ, wá lati “gbe ofin ga, ki o si jẹ ki o lọwọ.” O fi otitọ inu ṣe iṣẹ ti Ọlọrun gbe fun, a si gba a laaye lati ri awọn aṣeyọri ti o logo. Ni opin igbesi aye rẹ, ti o lé ni ọgọrin ọdun—o fi ó le ni aadọta ọdun ṣe iṣẹ oniwaasu arinkaakiri—awọn atẹle rẹ ju aabọ miliọnu eniyan lọ. Ṣugbọn ọpọ awọn eniyan ti a gbe dide lati inu iparun ati ibajẹ ẹṣẹ lati gbe igbesi aye ti o ga si ti o tun jẹ mimọ nipasẹ iṣẹ rẹ, ati iye awọn ti wọn ri iriri kikun ti o jinlẹ si nipasẹ ikọni rẹ, ni a ko le mọ titi ti gbogbo idile awọn ti a rapada yoo fi ko ara wọn jọ pọ ni ijọba Ọlọrun. Igbesi aye rẹ fun wa ni ẹkọ ti o ṣe iyebiye fun gbogbo Kristẹni. I ba ti dara to bi a ba le fi igbagbọ ati irẹlẹ, itara ti ki i kaarẹ, ìfi ara ẹni rubọ, ati ifọkansin iranṣẹ Kristi yii han ninu awọn ijọ lonii!

15

Bibeli Ati Idoju Ijọba Bolẹ Ni France

Ni ọrundun kẹrindinlogun, iṣẹ Atunṣe gbe Bibeli ti a ṣi silẹ han awọn eniyan, o n wa ọna lati wọ gbogbo orilẹ ede ti o wa ni Europe. Awọn orilẹ ede kan fi ayọ gba a gẹgẹ bi iranṣẹ lati Ọrun wa. Ni awọn ibomiran, ẹsin popu ṣe aṣeyọri pupọ lati mase jẹ ki a gba a wọle; a si ti ilẹkun mọ imọlẹ imọ Bibeli pẹlu gbogbo agbara ti n gbéni soke rẹ. Ninu orilẹ ede kan, bi o tilẹ jẹ wipe imọlẹ ri aaye wọle, okunkun ko le bori rẹ. Fun ọpọ ọdun, otitọ ati èké jijọ n jijadu fun ipo ọga. Ni ikẹyin iwa buburu bori, a si ti otitọ Ọrun sita. "Eyi ni idajọ naa pe, imọlẹ wa si inu aye, ṣugbọn awọn eniyan fẹran okunkun ju imọlẹ lọ." Johanu 3:19. A fi orilẹ ede naa silẹ lati kore ayọrisi ohun ti o yan. A mu ìkóni-nijanu Ẹmi Ọlọrun kuro lara awọn eniyan ti wọn gan ẹbun oore ọfẹ Rẹ. A gba iwa buburu laaye lati dagba. Gbogbo aye si ri eso mimọọmọ ko otitọ silẹ.

Ogun atako si Bibeli, ti o tẹsiwaju fun ọpọlọpọ ọdun ni France, wa pari si awọn iṣẹlẹ idoju ijọba bolẹ. Iṣẹlẹ buburu yii jẹ abayọri ti a ko le yẹ kuro nitori bi Romu ti ṣe tẹ Iwe Mimọ ri. O fi apẹẹrẹ abayọri ọgbọn iselu popu han kedere, eyi ti araye ti i ri ri—apẹẹrẹ atubọtan eyi ti ikọni Romu ti n tẹ si fun bi i o le ni ẹgbẹrun ọdun.

Awọn woli ti ṣe asọtẹlẹ bi a yoo ti tẹ Iwe Mimọ rì ni akoko iṣejọba popu; Olufihan si tọka si awọn atubọtan buburu ti yoo ṣẹlẹ si France latari ijẹgaba "ọkunrin ẹṣẹ."

Angẹli Oluwa wipe: "Wọn yoo si tẹ ilu mimọ naa mọlẹ labẹ atẹlẹsẹ fun oṣu meji-le-logoji. Emi yoo si fun awọn ẹleri mi mejeeji ni agbara, wọn o wọ aṣọ ọfọ, wọn o si sọtẹlẹ fun ẹgbẹfa ọjọ o le ọgọta. . . . Nigba ti wọn ba si ti pari ẹri wọn, ẹranko ti o n ti inu ọgbun goke wa nì yoo

ba wọn jagun, yoo si ṣẹgun wọn, yoo si pa wọn. Oku wọn yoo si wa ni igboro ilu nla ni, ti orukọ rẹ n jẹ Sodomu ati Ijibiti ni ti ẹmi, nibi ti a ti kan Oluwa wọn mọ agbelebu. . . . Awọn eniyan ti n gbe ori ilẹ aye yoo si yọ lori wọn, wọn o si ṣe ariya, wọn o si ta ara wọn lọrẹ; nitori ti awọn woli naa dá awọn ti n gbe ori ilẹ aye lóró. Lẹyin ọdun mẹta ati aabo naa, Ẹmi iye lati ọdọ Ọlọrun wa wọ inu wọn, wọn si dide duro ni ẹsẹ wọn; ibẹru nla si de ba awọn ti o ri wọn.” Ifihan 11:2—11.

Akoko ti a darukọ nibi—”ogoji oṣu o le meji,” ati “ẹgbẹfa ọjọ o le ọgọta”—jẹ n kankan naa, wọn jijọ duro fun akoko ti ijọ Kristi yoo jiya labẹ inira lati ọdọ Romu ni. Ẹgbẹfa o le ọgọta ọdun (1260) ti ijọba popu bẹrẹ ni A. D. 538, yoo si pari ni 1798. Ni akoko naa, ẹgbẹgun France wọ inu Romu lọ, wọn mu popu ni ẹlẹwọn, o si ku ni ilẹ ajeji. Bi o tilẹ jẹ wipe a yara yan popu miran lẹyin eyi, agbara popu ko pọ to iru eyi ti o ni tẹlẹ mọ lati igba yẹn lọ.

Ki i ṣe gbogbo akoko 1260 ọdun naa ni a fi ṣe inunibini si ijọ. Ọlọrun ninu aanu Rẹ fun awọn eniyan, gé akoko idanwo gbigbona naa kuru. Ni sisọtẹlẹ nipa “inira nla” ti yoo ba ijọ,Olugbala sọ wipe: “Ayafi bi a ba gé ọjọ naa kuru, ko si ẹni ti yoo le là á: ṣugbọn nitori awọn ayanfẹ ni a o fi ge ọjọ wọn-ọn ni kúrú.” Matiu 24:22.

Nipa awọn ẹlẹri mejeeji naa, woli naa tun sọ wipe: “Awọn wọnyi ni igi olifi meji, ati ọpa fitila meji ti wọn n duro niwaju Ọlọrun aye.” Olorin sọ wipe, “Ọrọ Rẹ ni atupa si ẹsẹ mi, ati imọlẹ si ọna mi.” Ifihan 11:4; O. Dafidi 119:105. Awọn ẹlẹri mejeeji wọnyi duro fun Majẹmu Laelae ati Tuntun. Awọn mejeeji jẹ ẹri ti o ṣe pataki nipa ibẹẹrẹ ati ìwà titi lae ofin Ọlọrun. Awọn mejeeji ni wọn jẹ ẹlẹri si eto igbala. Awọn apẹẹrẹ, irubọ, ati asọtẹlẹ Majẹmu Laelae tọka si Olugbala ti n bọ. Awọn Iyinrere ati Episteli inu Majẹmu Tuntun sọ nipa Olugbala ti O wa ni ọna gan an ti awọn apẹẹrẹ ati asọtẹlẹ gba sọ ọ.

“Won yoo sọtẹlẹ fun ẹgbẹfa o le ni ọgọfa (1260) ọjọ, ninu aṣọ ọfọ.” Ni igba ti o pọ julọ ninu akoko yii, awọn ẹlẹri Ọlọrun wa ninu ipò okunkun. Agbara ijọ padi wá ọna lati fi ọrọ otitọ pamọ kuro ni ọdọ awọn eniyan, ki o si gbe awọn ẹlẹri eke lati tako ẹri rẹ ka iwaju wọn. Nigba ti a aṣẹ ẹsin ati ti oṣelu tako Bibeli; nigba ti a ṣi awọn ẹri inu rẹ lo, ti a si ṣe ohun gbogbo ti eniyan ati awọn ẹmi aimọ le ṣe lati yi ọkan awọn eniyan kuro lara rẹ; nigba ti a dọdẹ awọn ti wọn n waasu rẹ, ti a n tu aṣiri wọn, ti a n fi iya jẹ wọn, ti a n tì wọn mọ yara inu tubu, ti wọn n di ajẹriku nitori igbagbọ wọn, tabi ti o di dandan fun wọn lati salọ si ibi aabo ni awọn oke, tabi ninu iho ilẹ ati iho inu apata—ni akoko naa ni awọn ẹlẹri tootọ n sọ asọtẹle ninu aṣọ ọfọ. Sibẹ wọn tẹsiwaju ninu ẹri wọn ni gbogbo akoko 1260 ọdun naa. Ni akoko ti o dudu julọ awọn olootọ eniyan wà ti wọn fẹran ọrọ Ọlọrun ti wọn si n

jowu nitori ogo Rẹ. A fun awọn iranṣẹ olootọ wọnyi ni ọgbọn, agbara ati aṣẹ lati ṣe ikede otitọ Rẹ ninu gbogbo akoko yii.

“Bi ẹnikẹni ba fẹ pa wọn lara, ina ti ẹnu wọn jade, o si pa awọn ọta wọn run: bi ẹnikẹni ba fẹ pa wọn lara, bayii ni a o ṣe pa a.” Ifihan 11:5. Awọn eniyan ko le tẹ ofin Ọlọrun loju laisi ijiya. A ṣe itumọ gbolohun ẹlẹru yii ninu abala ti o kẹyin ninu iwe Ifihan: “Emi n jẹri fun olukuluku ẹni ti o gbọ ọrọ isọtẹlẹ iwe yii pe, Bi ẹnikẹni ba fi kun wọn, Ọlọrun yoo fi kun awọn iyọnu ti a kọ si inu iwe yii fun un: bi ẹnikẹni ba si yọ kuro ninu ọrọ isọtẹlẹ iwe yii, Ọlọrun yoo mu ipa tirẹ kuro ninu iwe iye, ati kuro ninu ilu mimọ naa, ati kuro ninu awọn ohun ti a kọ si inu iwe yii.” Ifihan 22:18, 19.

Iru awọn ikilọ bawọnyi ni Ọlọrun ṣe lati maṣe jẹ ki eniyan o yi ohun ti O fihan tabi ti O palaṣẹ pada ni ọnakọna. Awọn ikilọ alagbara wọnyi ni itumọ fun gbogbo ẹni ti n dari awọn eniyan lati fi oju tẹnbẹlu ofin Ọlọrun. Wọn nilati jẹ ki awọn ti wọn n kede wipe ko ṣe pataki boya a ṣe igbọran si ofin Ọlọrun tabi boya a ko ṣe igbọran si o bẹru, ki wọn si wariri. Gbogbo awọn ti wọn gbe ero wọn ga ju ifihan Ọlọrun lọ, gbogbo awọn ti wọn yi itumọ Iwe Mimọ ti o han kedere pada lati le tẹ ara wọn lọrun, tabi lati le wa ni ibamu pẹlu aye, n gbe ẹru wuwo le ara wọn lori. Ọrọ ti a kọ silẹ, ofin Ọlọrun, yoo ṣe odiwọn iwa gbogbo eniyan, yoo si ṣe idalẹbi fun gbogbo awọn ti odiwọn ti ko le baku yii ba ri wipe wọn ko kun oju oṣuwọn.

“Nigba ti wọn ba pari [n pari] ẹri wọn.” Akoko ti awọn ẹlẹri meji yii yoo fi sọtẹlẹ pẹlu aṣọ ọfọ pari ni 1798. Bi wọn ti n sunmọ opin iṣẹ wọn ninu ifarasin, agbara ti a ṣe afihan rẹ bi “ẹranko ti o jade wa lati inu ọgbun ainisalẹ” a ba wọn jagun. Ni ọpọlọpọ awọn orilẹ ede ni Europe, Satani ni o n dari agbara ti o n ṣe idari ninu ijọ ati ilu nipasẹ ẹsin ijọ padi. Ṣugbọn nibi, a ṣe afihan agbara Satani tuntun.

O jẹ iwuwasi Romu labẹ afarajọ wipe o n bọwọ fun Bibeli, lati ti i pá sinu ede ti a ko mọ, ati lati pa mọ kuro ni ọdọ awọn eniyan. Labẹ iṣakoso rẹ, awọn ẹlẹri meji naa sọtẹlẹ “ninu aṣọ ọfọ.” Ṣugbọn agbara miran—ẹranko ti o ti inu ọgbun ainisalẹ jade wa— yoo dide lati mọọmọ bá ọrọ Ọlọrun jagun.

“Ilu nla naa” nibi ti a gbe pa awọn ẹlẹri naa, ti oku wọn dubulẹ si ni a pe ni Ijibiti “ni ti ẹmi.” Ninu gbogbo awọn orilẹ ede ti a ri ninu itan Bibeli, Ijibiti ni o fi igboya sọ wipe ko si Ọlọrun alaaye ti o si tako awọn aṣẹ Rẹ. Ko si ọba ti o ṣọtẹ ni gbangba pẹlu afojudi si aṣẹ Ọrun bi ọba Ijibiti ti ṣe. Nigba ti Mose mu iṣẹ iranṣẹ wa si ọdọ rẹ ni orukọ Oluwa, Farao fi igberaga dahun wipe: “Tani Jehofa, ti emi yoo fi gbọ ohùn Rẹ lati jẹ ki Israeli o lọ? Emi ko mọ Jehofa, bẹẹ ni n ko si ni jẹ ki Israeli o lọ.” Eksodu 5:2. Eyi ni igbagbọ wipe ko si Ọlọrun, orilẹ ede

naa ti a fi Ijibiti wé yoo sọrọ lati kọ aṣẹ Ọlọrun alaaye silẹ ni ọna kan naa, yoo si fi iru ẹmi aigbagbọ ati ipenija kan naa han. “Ilu nla naa” ni a tun fi we Sodomu “ni ti ẹmi”. Iwa ibajẹ Sodomu ni riru ofin Ọlọrun fi ara han ni pataki julọ ninu iwa aileko-ara-ẹni nijanu. Ẹṣẹ yii ni yoo jẹ iwa ti o han kedere julọ ninu orilẹ ede naa ti yoo mu alaye iwe mimọ yii ṣẹ.

Gẹgẹ bi ọrọ woli naa, nigba naa, ni akoko diẹ ṣaaju ọdun 1798 agbara kan ti ipilẹṣẹ ati iwuwasi rẹ jẹ ti Satani yoo dide lati ba Bibeli jagun. Ninu ilẹ naa ti a o ti pa ẹri awọn ẹlẹri Ọlọrun mejeeji lẹnu mọ, iru aigbagbọ ninu Ọlọrun ti Farao, ati iwa aileko-ara-ẹni-nijanu ti Sodomu yoo fi ara han.

Asọtẹlẹ yii ri imuṣẹ ti o ṣe rẹgi, ti o si yanilẹnu ninu itan France. Ni akoko idoju ijọba bolẹ ni 1793, “araye, fun igba akọkọ gbọ, ti agbajọpọ eniyan, ti a bí, ti a si kọ ni ilana ọlaju, ti wọn si ni ojuṣe lati ṣe idari ọkan ninu awọn orilẹ ede ti o dara julọ ni Europe, gbe ohùn wọn soke lati kọ otitọ ti o ṣe pataki julọ ti o wa ninu ọkan eniyan silẹ, wọn si fi ohùn ṣọkan lati kọ igbagbọ ati ijọsin Ọlọrun silẹ.” “France nikan ṣoṣo ni orilẹ ede naa ti a ri akọsilẹ rẹ ni gbogbo aye, gẹgẹ bi orilẹ ede, ti o gbe ọwọ rẹ soke ni iṣọtẹ si Ẹlẹda gbogbo agbala aye. Ọpọlọpọ awọn asọrọ odi, ọpọlọpọ awọn alaigbagbọ ni wọn ti wà, ti wọn si n wà ni England, Germany, Spain, ati ni ibi gbogbo; ṣugbọn France duro yatọ ninu itan aye, gẹgẹ bi ilu kan ṣoṣo ti o kede wipe ko si Ọlọrun nipasẹ aṣẹ igbimọ aṣofin rẹ, ti gbogbo awọn ti wọn wa ni olu ilu rẹ, ati ọpọlọpọ awọn eniyan ni ibomiran, ọkunrin ati obinrin, n jo ti wọn si n kọrin pẹlu ayọ nitori pe wọn gba ikede naa.”

France tun ṣe afihan awọn iwa ti wọn mu Sodomu yatọ ni ọna pataki. Ni akoko idoju ijọba bolẹ ipa ìwà ailojuti ati iwa ibajẹ fi ara han ni ọna ti o dabi eyi ti o mu iparun ba awọn ilu ti wọn wa ni pẹtẹlẹ. Awọn opitan si sọ nipa igbagbọ ti o wipe ko si Ọlọrun ati iwa aileko-ara-ẹni-nijanu ti France, gẹgẹ bi a ti sọ ọ ninu isọtẹlẹ: “Ni ibaṣepọ timọtimọ pẹlu awọn ofin ti wọn tako ẹsin wọnyi ni eyi ti o din ibaṣepọ ti igbeyawo ku—ibaṣepọ ti o jẹ mimọ julọ ti eniyan le ṣe, eyi ti iwa titi lae rẹ maa n fun awujọ lokun—si ipo adehun lasan laarin ilu ti ko duro titi lae, eyi ti awọn eniyan meji le wọ inu rẹ ki wọn si tuka bi wọn ṣe fẹ. . . . Bi awọn eniyan buburu ba n wa ọna lati ba ohunkohun ti o lọwọ, ti o gbayi, ti o si duro titi lae ninu ile jẹ ni ọna ti o lagbara julọ, ki wọn tun ri idaniloju wipe iwa buburu ti wọn fẹ da silẹ yoo wà lati iran de iran, wọn ko le ri ọna miran ti o dara bii biba igbeyawo jẹ. . . . Sophie Arnoult, eléré itage ti o lokiki nitori awọn ọrọ ti wọn panilẹrin, ti wọn si mu ọgbọn dani ti o sọ, ṣe apejuwe igbeyawo inu ilu naa gẹgẹ bi ‘ami majẹmu agbere.’”

“Nibi ti a ti kan Oluwa wa mọ agbelebu.” France tun mu apejuwe asọtẹlẹ yii wa si imuṣẹ. Ko si ilu ti a ti fi ẹmi ikorira han si Kristi bii ti France. Ko si orilẹ ede ti otitọ ti ṣe alabapade iru atako kikoro ti o si buru bẹẹ. Ninu inunibini ti France ṣe si awọn ti wọn gbagbọ ninu iyinrere, o kan Kristi mọ agbelebu ninu awọn ọmọ ẹyin Rẹ.

Lati igba de igba ni a ti n ta ẹjẹ awọn eniyan mimọ silẹ. Nigba ti awọn Waldenses fi ẹmi wọn lelẹ ni awọn oke Piedmont “fun ọrọ Ọlọrun, ati fun ẹri Jesu Kristi,” awọn arakunrin wọn, awọn Albigenses ti France jẹ iru ẹri kan naa fun otitọ. Ni igba iṣẹ Atunṣe, a pa awọn ọmọleyin rẹ pẹlu ifiyajẹni ti o buru jai. Ọba ati awọn ijoye, awọn obinrin ti a bi ni ile ọla ati awọn arẹwa obinrin, awọn ohun amuyangan ati akọni ilu, pejọ pọ lati wo ijiya awọn ajẹriku fun Kristi. Awọn Huguenots onigboya, ni jijagun fun awọn ẹtọ ti wọn ṣe pataki si ọkan eniyan, wọn tu ẹjẹ wọn silẹ ni oju ija alagbara. A ri awọn Protestant gẹgẹ bi ọdaran, a si da iye lé orí wọn, a tun n dọdẹ wọn bi ẹranko igbẹ.

“Ijọ ni Aginju,” awọn arọmọdọmọ perete ti wọn ṣẹ wa lati ọdọ awọn Kristẹni igba atijọ ṣi wa ni France titi di ọrundun kejidinlogun, ti wọn n sapamọ ninu awọn oke ni iha gusu, nitori pe wọn si fẹran igbagbọ awọn baba wọn. Bi wọn ba ti fẹ pejọ pọ ni aṣalẹ ni ẹba oke tabi ninu aginju ti o farasin, awọn ẹgbẹgun a le wọn kaakiri, wọn a si wọ wọn sinu igbe aye igbekun ninu ibi ifini-ṣiṣẹ. A de awọn ti wọn ni iwa mimọ julọ, ti wọn dara julọ, ti wọn ni oye julọ, mọ ẹwọn, pẹlu ifiyajẹni ti o buru, laarin awọn jaguda ati aṣekupani. Awọn miran ti a ṣe aanu fun ni a pa laisi ija, laini ihamọra, laini oluranlọwọ, bi wọn ti wa ni ori eekun wọn ti wọn n gbadura. Ọpọ awọn arugbo lọkunrin, ati lobinrin ti ko ni aabo, ati awọn ọmọ alailẹṣẹ ni a fi oku wọn silẹ ninu ibi ipade wọn. Bi a ba gba ẹba oke tabi inu igbo ti wọn ti saba maa n pade kọja, ki i ṣe ohun ti o yanilẹnu ni “lati ri ni bi i iwọn ẹṣẹ mẹrin, awọn oku eniyan ninu igbo, awọn oku ti a so rọ lori igi.” A sọ ilẹ wọn di ahoro pẹlu ida, aake, ati igi idana; “o di aginju nla ti o dakẹ roro.” “A kò wu awọn iwa buburu yii . . . ni igba oju dudu, ṣugbọn ni akoko ọlaju, ni igba ijọba Louis XIV. A ti n kọ ẹkọ ijinlẹ ni akoko naa, iwe kikọ n gbilẹ, awọn alaṣẹ inu aafin ati ni ilu jẹ ọmọwe ati awọn ti wọn ni ẹbun ọrọ sisọ, ti wọn fi iwa irẹlẹ ati ifẹ han.”

Ṣugbọn eyi ti o ni ika julọ ninu akọsilẹ iwa ika, eyi ti o buru julọ ninu awọn iwa buburu ninu gbogbo awọn ọdun ti wọn lẹru julọ ni Ipaniyan ti Batolomiu mimọ. Araye si n wariri nigba ti wọn ba ranti awọn iṣẹlẹ buburu ti ipaniyan ni ipakupa ni ọna ójo naa. Awọn alufa ẹsin Romu rọ ọba France lati fi ọwọ si iṣẹ laabi naa. Agogo ti n dun ni oru ganjọ ni aami lati bẹrẹ iṣẹ ipaniyan naa. Awọn Protestant ni iye

wọn, ti n sun jẹjẹ ninu ile wọn, ti wọn gbẹkẹle ileri ọba wọn ni a wọ jade laisi ikilọ, ti a si pa wọn laiṣe wipe ija wà.

Bi Kristi ti jẹ adari ti a ko ri fun awọn eniyan Rẹ lati oko ẹru Ijibiti, bẹẹ gẹgẹ ni Satani ṣe jẹ adari ti a ko ri fun awọn eniyan rẹ ninu iṣẹ laabi ti sisọ awọn ajẹriku di pupọ yii. Iṣẹ ipaniyan nipakupa yii tẹsiwaju ninu ilu Paris fun ọjọ meje, ti ti ọjọ mẹta akọkọ, kun fun ibinu ti a ko le ṣalaye. Ki i si ṣe ninu ilu naa nikan ni a ti ṣe eyi, ṣugbọn nipasẹ aṣẹ ọba pataki, a tan an de awọn ilu ati agbegbe ti a ba ti ri awọn Protestant. A ko bọwọ fun ọjọ ori tabi boya eniyan jẹ okunrin tabi obinrin. Ati ọmọ kekere jojolo, ati agbalagba ti o ni iwu lori, ko si ẹni ti a da silẹ. Ọlọrọ ati agbẹ aroko, agbalagba ati ọmọde, ọmọ ati iya ni a ge lulẹ papọ. Iṣẹ ipaniyan yii tẹsiwaju kaakiri gbogbo ilẹ France fun oṣu meji. Ẹgbẹrun lọna aadọrin (70,000) awọn ogo orilẹ ede naa ni wọn ṣegbe.

“Nigba ti iroyin ipaniyan nipakupa yii de Romu, idunnu awọn alufa ko lopin. Kadina ti ilu Lorraine fi ẹgbẹrun kan owo ta iranṣẹ ti o mu iroyin naa wa lọrẹ; ibọn nla ti o wa ni St Angelo dun fun ajọyọ; agogo si n dun lati inu gbogbo ile ijọsin; ina ti a da fun ariya naa sọ aṣalẹ di ọsan; Gregory XII ati awọn kadina ati awọn oloye ijọ ti wọn yi i ka ṣe iwọde nla lọ si ile ijọsin St Louis, nibi ti kadina ti Lorraine ti kọ orin Te Deum (Si Ọlọrun). . . . A rọ owo ẹyọ lati ṣe iranti ipaniyan nipakupa yii; ni Vatican, a ṣi lè ri awọn aworan mẹta ti Vasari, ti o n ṣe alaye bi a ti kọlu ọgagun oju omi kan, ọba ti o n pète ipaniyan naa ninu igbimọ, ati ipaniyan naa funra rẹ. Gregory fi òdòdó wura ranṣẹ si Charles; ọsu mẹrin lẹyin ipaniyan yii, . . . o fi idẹra tẹti silẹ si iwaasu kan lati ẹnu alufa ilẹ French kan, . . . ti o sọ nipa “ọjọ naa ti o kun fun idunu ati ayọ, nigba ti baba mimọ gba iroyin naa, o wọ inu ipo ọlọwọ lati lọ dupe lọwọ Ọlọrun ati St Louis.”

Ẹmi nla kan naa ti o fa ipakupa ti Batolomiu mimọ ni o dari awọn iṣẹlẹ inu idoju ijọba bolẹ. A sọ wipe opurọ ni Jesu Kristi, ariwo kan ṣoṣo ti gbogbo awọn alaigbagbọ ilẹ France n kigbe naa ni, “Fún eniyankeniyan naa pa,” wọn n sọ nipa Kristi. Ọrọ odi ti a sọ si Ọrun ati iwa ibi ti o buru jọjọ jijọ maa n kọwọ rin ni, ti á si gbe awọn ti wọn buru julọ ninu awọn eniyan, awọn ti wọn ti yigbì ninu iwa ika ati iwa ọdaran ga si oke tente. Ninu gbogbo iwọnyi, a ṣe ijọsin ti o ga julọ fun Satani; nigba ti a kan Kristi mọ agbelebu ninu iwa otitọ, iwa mimọ, ati ifẹ alaini-imọ-ti-ara-rẹ-nikan Rẹ.

“Ẹranko naa ti o jade lati inu ọgbun ainisalẹ wá yoo ba wọn jagun, yoo si ṣẹgun wọn, yoo si pa wọn.” Agbara ti ko gbagbọ ninu Ọlọrun yii ti o ṣe akoso ni ilẹ France ni akoko idoju ijọba bolẹ ati akoso ẹru, bá Ọlọrun ati ọrọ Rẹ jagun ni ọna ti araye koi tii ri ri. Ile igbimọ aṣofin pa

ijọsin Ọlọrun rẹ. A ko awọn Bibeli jọ, a si dana sun wọn ni itagbangba pẹlu gbogbo ẹgan ti a le ṣe si. A tẹ ofin Ọlọrun mọlẹ. A pa gbogbo awọn ohun ti Bibeli fi lelẹ rẹ. A kọ ọjọ isinmi ọsọọsẹ silẹ, dipo rẹ, a ya gbogbo ọjọ kẹwa sọtọ fun ariya ati isọrọ odi. A fi ofin de Itẹbọmi ati Ounjẹ Alẹ Oluwa. A si lẹ awọn ikede mọ awọn ibi isinkusi nibi ti gbogbo eniyan yoo ti ri wipe orun ayeraye ni iku jẹ.

A sọ wipe ibẹru Ọlọrun ki i ṣe ibẹrẹ ọgbọn rara, bikoṣe ibẹrẹ omugọ. A fi ofin de gbogbo ijọsin ẹsin, ayafi ti ominira ati ti orilẹ ede. “A mu bisọbu ti ofin fi ọwọ si ni Paris jade lati wa ko ipa pataki ninu iwa alafojudi ati alabuku ti ko nitumọ ti a ti i wu ri niwaju awọn aṣoju orilẹ ede. . . . A mu wa siwaju awọn ero lati sọ fun igbimọ naa wipe ẹsin ti oun ti fi kọni fun ọpọlọpọ ọdun, ni gbogbo ọna jẹ ọgbọn ẹwẹ awọn alufa, ti ko ni ipilẹ ninu itan tabi otitọ mimọ. O kọ iwalaaye Ọlọrun, ẹni ti a tori isin Rẹ yaa sọtọ silẹ ni ọna ti o lọwọ ti o si han kedere, o si fi ara rẹ jin fun ijọsin ominira, ibadọgba, iwa rere ati iwa ọmọluabi. O wa ko awọn aṣọ alufa rẹ si ori tabili, olori igbimọ naa si di mọ gẹgẹ bi ami ibadọrẹ. Diẹ ninu awọn alufa ti wọn ya apẹyinda naa tẹle apẹẹrẹ alufa yii.”

“Awọn ti wọn n gbe ori ile aye yoo si yọ nitori wọn, wọn yoo ṣe ajọyọ, wọn yoo si fi ẹbun ranṣẹ si ara wọn; nitori ti awọn woli mejeeji wọnyi n da awọn ti n gbe ori ilẹ aye loro.” France alaigbagbọ ti pa ohùn ibawi awọn ẹlẹri Ọlọrun mejeeji yii lẹnu mọ. Ọrọ otitọ ti dubulẹ ninu igboro rẹ, awọn ti wọn korira idilọwọ ati ilana ofin Ọlọrun si n yọ. Awọn eniyan n pe Ọba ọrun nija ni gbangba. Bi awọn ẹlẹṣẹ igbaani, wọn n kigbe wipe: “Bawo ni Ọlọrun ti ṣe mọ? imọ ha wa ninu Ọga Ogo bi?” O. Dafidi 73:11.

Pẹlu igboya asọrọ odi ti o kọja ohun ti eniyan le gbagbọ, ọkan ninu awọn alufa ẹgbẹ tuntun naa sọ wipe: “Ọlọrun bi o ba wa laaye, gbẹsan nitori orukọ Rẹ ti wọn bajẹ. Mo pe Ọ nija! O dakẹ; O o tobẹ lati ran ara Rẹ. Lẹyin eyi, tani yoo gbagbọ ninu iwalaaye Rẹ?” Eyi dabi àtunsọ ohun ti Farao sọ: “Tani Jehofa, ti emi yoo fi gbọ ohùn Rẹ?” “Emi ko mọ Jehofa!”

“Aṣiwere wi ni ọkan rẹ pe, Ko si Ọlọrun.” O. Dafidi 14:1. Oluwa tun sọ nipa awọn ti wọn n yi otitọ Rẹ pada bayi pe: “Iwa were wọn han si gbogbo eniyan.” 2 Timoti 3:9. Lẹyin ti France kọ ijọsin Ọlọrun alaaye, “Ẹni nla ati Ẹni giga ti n gbe inu ayeraye” silẹ, akoko diẹ ni o ku lati tẹri sinu iwa ibọrisa ti o n yẹpẹrẹ ẹni, nipa jijọsin Ọlọrunbinrin Imọ, tí obinrin oniwakuwa kan duro fun. Eyi si ṣẹlẹ niwaju igbimọ aṣoju orilẹ ede naa, ati nipasẹ awọn alaṣẹ iṣejọba ati iṣofin rẹ ti o ga julọ! Opitan kan sọ wipe: “Ọkan lara awọn eto akoko wèrè yii kò lẹgbẹ ninu aitọ ati ailọwọ. A ṣi ilẹkun ile igbimọ naa silẹ fun ẹgbẹ awọn

akọrin kan, awọn alaṣẹ ilu ti kọkọ ṣaaju wọn wọle, wọn n kọ orin ni iyin si ominira, wọn si mu obinrin ti wọn bò loju wọle, ẹni ti wọn pe ni Ọlọrunbinrin Imọ, gẹgẹ bi ohun ti won yoo maa jọsin. Nigba ti a mu wọ aarin irin, wọn ṣi oju rẹ pẹlu èтò nla, wọn si fi si ọwọ ọtun olotu, nigba ti gbogbo eniyan ri wipe oun ni ọmọbinrin ti n jo ninu ile orin. . . . Igbimọ apapọ ti orilẹ ede France jọsin fun ẹni yii nigbangba, ẹni ti wọn ri gẹgẹ bi aṣoju imọ ti wọn n sin.

"Eto ailọwọ ti o n panilẹrin yii ni ọna kan ti a n gba ṣe e; a si tun ìfisípò Ọlọrunbinrin imọ ṣe, ti a tun ṣe awokọṣe rẹ ni gbogbo orilẹ ede naa ni awọn ibi ti awọn olugbe rẹ ba ti fẹ fihan wipe wọn de oke tente ninu gbogbo ilana idoju ijọba bolẹ."

Sọrọsọrọ ti o ṣe afihan isin Imọ sọ wipe: "Ẹyin aṣofin! Irokuro ẹsin ti fi aye silẹ fun imọ. Oju rẹ ti o ṣu ko le wo itansan imọlẹ. Loni ero nla pejọ pọ si abẹ ile nla yii fun igba akọkọ lati wa tun otitọ naa sọ. Nibi ni awọn eniyan ilẹ France ti ṣe ajọyọ ijọsin tootọ kan ṣoṣo,—ti Ominira, ti Imọ. Nibẹ ni a ti ṣe ipinu fun ilọsiwaju orilẹ ede. Nibẹ ni a ti fi awọn ère ti ko ni ẹmi silẹ lati tẹle Imọ, lati tẹle aworan ti o ni ẹmi, eyi ti o dara julọ ninu iṣẹda."

Nigba ti a mu ọlọrunbinrin yii wa sinu igbimọ, sọrọsọrọ kan mu lọwọ dani, o yiju si igbimọ naa o sọ wipe: "Ẹyin ẹlẹran ara, ẹ maṣe wariri mọ niwaju àrá ti ko lagbara ti Ọlọrun tí ibẹru yin da silẹ. Lati akoko yii lọ, ẹ maṣe mọ Ọlọrun miran mọ ayafi Imọ. Mo fi aworan ti o niyi julọ, ti o tun mọ julọ fun yin; bi ẹ ba fẹ ni ère, ẹ maa rubọ si ohunkohun ti o ba dabi eyi. . . . Ẹ wolẹ niwaju Aṣofin Agba ti ominira oh! Iboju Imọ!"

Lẹyin igba ti olotu dìmọ ọlọrunbinrin naa tan, a gbe si ori ọkọ nla kan, a si gba aarin ọpọ ero kọja lọ si katidra ti Notre Dame, lati lọ duro ni ipo Ọlọrun. A gbe si ori pẹpẹ giga ti o wa nibẹ, gbogbo awọn ti wọn wa nibẹ si jọsin rẹ.

Laipẹ lẹyin eyi, a sun Bibeli nina nigbangba. Ni igba kan, "Ẹgbẹ ti o lokiki ti ibi ìkó-ohun-iranti-pamọ-si" wọ gbọngan ilu lọ, wọn n kigbe wipe, "Vive la Raison!"(Ki imọ ki o wa laaye) wọn gbe àjókù awọn iwe kan, iwe orin, iwe adura ati Majẹmu Laelae ati Tuntun, eyi ti olotu sọ nipa wọn wipe, "a ṣe etutu gbogbo iwa were eyi ti wọn jẹ ki iran eniyan o wu ninu ina nla."

Ilana popu ni o bẹrẹ iwa ti aigbagbọ ninu Ọlọrun n pari. Ilana Romu ti pese awọn aaye silẹ ni aarin awujọ, ninu iṣelu, ati ninu ẹsin, ti wọn n ti France lọ sinu iparun. Nigba ti awọn onkọwe n sọ nipa awọn iṣẹlẹ ẹlẹru ti igba idoju ijọba bolẹ, wọn sọ wipe ori ijọ ati itẹ ni o yẹ ki a di ẹsun awọn aṣeju wọnyi lé. Nitootọ, ori ijọ ni o yẹ ki a di wọn le. Ẹsin popu ti jẹ ki ọkan awọn ọba o tako iṣẹ Atunṣe, gẹgẹ bi ọta ade

ati ohun ti o le fa idarudapọ ti o le ko ewu ba alaafia ati iṣọkan orilẹ ede. Ọgbọn ẹwẹ Romu ni wipe nipasẹ eyi iwa onroro ati inira ti o ga julọ yoo wá lati ori itẹ.

Ẹmi ominira maa n tẹle Bibeli ni. Nibikibi ti a ba ti gba iyinrere, iyè awọn eniyan maa n soji. Wọn a bẹrẹ si ni ja ide ti o dè wọn ni igbekun mọ aimọkan, iwa ibajẹ, ati igba ohun asan gbọ sọnu. Wọn a bẹrẹ si nii ronu, wọn a si wuwa bi eniyan. Awọn ọba ri eyi, wọn si wariri fun iwa onroro wọn.

Romu ko lọra lati ru ibẹru ojowu wọn soke. Popu sọ fun adele ọba France ni 1525 wipe: "Ki i ṣe wipe wèrè yii [esin Protestant] yoo ko idarudapọ ati iparun ba ẹsin nikan, ṣugbọn ati gbogbo agbara, oye, ofin, èto, ati ipo pẹlu." Ọdun diẹ lẹyin eyi, aṣoju popu ṣe ikilọ fun ọba wipe: "Alagba, maṣe jẹ ki a tan ọ jẹ. Awọn Protestant a da oju gbogbo eto iṣelu ati ẹsin bolẹ. . . . Itẹ wa ninu ewu gẹgẹ bi pẹpẹ ti wa pẹlu. . . . Afihan ẹsin tuntun gbọdọ mu ijọba tuntun wa." Awọn ẹlẹkọ nipa Ọlọrun naa ru aimọkan awọn eniyan soke nipa sisọ wipe ikọni Protestant "maa n tan awọn eniyan sinu iwa aimọkan, o si maa ru ifẹ fun nnkan tuntun soke; ki i jẹ ki ọba o ri ibọwọfun lati ọdọ awọn ọmọ ilu rẹ, o si n ko iparun ba ijọ ati ilu." Bayii ni Romu se ṣe aṣeyege lati le jẹ ki France o doju ija kọ iṣẹ Atunṣe. "Lati le ṣe atilẹyin fun itẹ, lati le pa awọn ijoye mọ, lati le daabo bo ofin ni a fi kọkọ yọ ida inunibini ni France."

Ohun kekere ni awọn alaṣẹ ri nipa atubọtan ipinu pataki yii. Ẹkọ Bibeli i ba gbin awọn igbagbọ ninu ododo, iwọntuwọnsi, otitọ, idọgba, ati aanu, awọn ti wọn jẹ gbongbo fun ilọsiwaju orilẹ ede si inu ọkan ati iye awọn eniyan. "Ododo ni i gbe orilẹ ede leke." Nipasẹ rẹ ni "a fi n fi idi itẹ mulẹ." Owe 14:34; 16:12. "Iṣẹ ododo yoo jẹ alafia;" ipa rẹ si ni, "idakẹjẹ ati idaniloju titi lae." Aisaya 32:17. Ẹnikẹni ti o ba ṣe igbọran si ofin Ọlọrun yoo bọwọ fun, yoo si ṣe igbọran si ofin orilẹ ede rẹ nitootọ. Ẹni ti o ba bẹru Ọlọrun yoo bọwọ fun ọba ni siṣe ohun ti o tọ ti o si bojumu si aṣẹ. Ṣugbọn France ti iya yoo jẹ ṣe ofin lati tako Bibeli, o si le awọn ọmọ ẹyin rẹ lọ. Lati igba de igba, awọn eniyan ti wọn mọ ohun ti o tọ, ti wọn jẹ olootọ eniyan, awọn ọlọpọlọ pipe, ti wọn ni okun iwa, ti wọn ni igboya lati jẹwọ igbagbọ wọn ati igbagbọ lati jiya nitori otitọ—fun ọpọ ọdun awọn wọnyi ṣiṣẹ bi ẹru ni ibi ifini ṣiṣẹ, wọn ṣegbe ni ibi idanasunni, tabi ki wọn jẹra ninu ile tubu. Ọgọọrọ awọn eniyan ni wọn wa aabo nipa sisa lọ; eyi si ṣẹlẹ fun aadọta le ni igba (250) ọdun lẹyin ti a bẹrẹ iṣẹ Atunṣe.

O sọwọn lati ri iran awọn ọmọ France kan laarin ọdun gbọọrọ naa ti ko ri bi awọn ọmọ ẹyin iyinrere ti n salọ kuro niwaju ibinu wèrè awọn oninunibini, ti wọn si n gbe oye, iṣẹ ọnà, imura siṣẹ, eto, ninu eyi ti wọn ti tayọ julọ, dani pẹlu wọn lati lọ bukun ibi ti wọn ba ti ri

aabo. Bi wọn ba si ti ṣe bukun ilẹ miran pẹlu awọn ẹbun rere wọnyi, bẹẹ gẹgẹ ni ilẹ wọn a ṣe padanu wọn. Bi gbogbo awọn ti a le kuro ba si wa ni France; ni ọgọrun mẹta (300) ọdun yii, bi ọgbọn isọwọ ṣiṣẹ awọn ti a lé kuro ba n ro oko rẹ; bi ọgbọn iṣẹ ọna won ba n jẹ ki ile iṣẹ rẹ o dagba laarin 300 ọdun yii; bi, laarin 300 ọdun yii, ijafafa wọn, ati agbara iwoye wọn ba n bukun ẹkọ iwe ati ẹkọ imọ ijinlẹ rẹ; bi ọgbọn wọn ba ti n ṣe idari igbimọ rẹ, ti igboya wọn n ja awọn ogun rẹ, ti idọgba wọn n ṣe awọn ofin rẹ, ti ẹsin Bibeli si n fun iwoye awọn eniyan lokun, ti o tun n ṣe idari ẹri ọkan awọn eniyan rẹ, iru ogo wo ni i ba yi France ka loni! Iru orilẹ ede nla, ọlọrọ ati alayọ—apẹẹrẹ fun awọn orilẹ ede—wo ni i ba jẹ!

"Ṣugbọn itara aimoye, ti o fọju ti ko si ṣe e ṣeṣọ le gbogbo olukọ iwa rere, gbogbo ọgagun ninu eto, gbogbo olugbeja itẹ nitootọ kuro ni ori ilẹ rẹ; o sọ fun awọn ti i ba jẹ ki orilẹ ede wọn o 'ni ogo ati okiki' ninu aye wipe, Yan eyi ti iwọ ba fẹ, ina tabi didi isansa. Ni ikẹyin isọdahoro orilẹ ede naa de gongo; ko si ẹri ọkan kankan lati tako mọ; ko si ẹsin kankan lati wọ lọ si ibi isunninina mọ; ko si ifẹran ilu ti a lè lé jade mọ." Idoju ijọba bolẹ, ati gbogbo iwa ipa rẹ, ni ayọrisi buburu rẹ.

"Pẹlu bi awọn Huguenots ti salọ, ifasẹyin ba lé ilẹ France. Awọn ilu ti wọn ti gbọrẹgẹtigẹ ninu iṣẹ siṣe di ahoro; awọn ilẹ ti wọn lọra pada di aginju; aimọkan ati ifasẹyin ninu iwa wiwu rọpo akoko idagbasoke ti ko lẹgbẹ. Paris di ile nla ti a ti n ṣe itọrẹ aanu, a ṣe isiro rẹ wipe, bi i 200,000 alaini ni wọn n gba itọrẹ aanu lati ọwọ ọba ni igba ti idoju ijọba bolẹ bẹrẹ. Awọn Jesuit nikan ni wọn n gbadun ninu orilẹ ede ti n jẹra naa, wọn si ṣe akoso pẹlu iwa onroro lori awọn ile ijọsin, ile ẹkọ, ọgba ẹwọn, ati ibi ifinisiṣẹ."

Iyinrere i ba fun France ni idahun si wahala iṣelu ati ti awujọ ti wọn ya ọgbọn awọn alufa, ọba, ati awọn aṣofin rẹ lẹnu, ti o wa ti orilẹ ede naa sinu ailofin ati iparun nikẹyin. Ṣugbọn labẹ iṣakoso Romu awọn eniyan padanu ikọni rere Olugbala nipa ifi-ara-eni-rubọ ati ifẹ aini-imọ-ti-ara-ẹni-nikan. A ti fa wọn kuro ninu siṣe iṣẹra ẹni nitori rere ẹlomiran. Awọn ọlọrọ ko ri ibawi fun bí wọn ti n ni awọn alaini lara, awọn alaini ko ri iranlọwọ fun imunisin ati irẹsilẹ wọn. Imọ-ti-ara-ẹni-nikan awọn ọlọrọ ati ti awọn alagbara tubọ n pọ si, o tubọ n fi ara han si, o si n tubọ n nini lara si. Fun ọpọ ọdun oju kokoro ati inakuna awọn ọlọrọ maa n jasi ilọnilọwọgba ti o nira fun awọn talaka. Awọn ọlọrọ ṣẹ awọn alaini, awọn alaini si korira awọn ọlọrọ pẹlu.

Ni ọpọlọpọ agbegbe, awọn ọlọrọ ni wọn ni ilẹ, awọn oṣiṣẹ si jẹ ayalẹlo lasan; ikawọ awọn onilẹ ni wọn wa, eyi si jẹ ki wọn o tẹsí ibeere wọn bi o ti wu ki o ga to. Wahala titọju ijọ ati ilu bọ si ori awọn

ti n ṣiṣẹ ati awọn otoṣi, wọn n san owo ori nla fun ilu ati awọn alufa. “A ka igbadun awọn ọlọrọ si ofin ti o ga julọ; awọn agbẹ ati alaini lè ma jẹun, eyi ko kan awọn ti n ni wọn lara rara. . . . A fi agbara mu awọn eniyan ni gbogbo ọna lati ṣe aajo fun ifẹ awọn onilẹ wọn nikan. Igbesi aye awọn agbẹ jẹ eyi ti o kun fun iṣẹ laisimi ati ijiya ti ko lopin; bi wọn ba gboya lati ṣe aroye, pẹlu ẹgan ni a maa n fi tẹti si wọn. Awọn ile idajọ saba maa n tẹti si ọlọrọ lati tako otoṣi; awọn onidajọ maa n gba abẹtẹlẹ; erokero to ba ti ọkan awọn ọlọrọ jade si maa n ni agbara ofin, nitori iwa ibajẹ ti o gbilẹ kan. Awọn owo ori ti awọn alaṣẹ ilu n gba ni ọna kan, ati eyi ti awọn alufa n gba ni ọna keji, eyi ti o n de apo ijọ tabi ti ijọba ko to idaji; inakuna ni ọna itẹra-ẹni-lọrun ni wọn a fi na eyi ti o ku. Awọn eniyan ti wọn si n sọ awọn ara ilu bii ti wọn di talaka yii kii san owo ori, ofin tabi aṣa ilu si fun wọn ni gbogbo ipo inu ilu. Awọn ti wọn ni anfani ninu ilu to 150,000, a si sọ ẹgbẹlẹgbẹ awọn to ku di alainireti ti o n gbe igbe aye irẹsilẹ nitori igbadun wọn.”

Aafin kun fun igbadun ati inakuna. Ifọkantan perete ni o wa laarin awọn eniyan ati awọn adari. Pẹlu ifura ni awọn eniyan fi n wo gbogbo iṣẹ ijọba wipe o ni ete kan ti wọn fẹ pa ati wipe o ni imọ-ti-ara-ẹni-nikan ninu. Fun o le ni aadọta ọdun ṣaaju idoju ijọba bolẹ, Louis XV ni o wa ni ori itẹ, ẹni ti a ri gẹgẹ bi ọba onimẹlẹ, alainilari ati onifẹkufẹ ara, ani ni iru akoko buburu yii. Pẹlu awọn alaṣẹ oniwa-ibajẹ ti wọn jẹ onroro, ati awọn ọmọ ilu alaimọkan ti a sọ di alaini, owo ijọba ko to ná, o si ti su awọn eniyan, a ko nilo oju woli lati ri rogbodiyan ti o de tan. Ọba, saba maa n da awọn olubadamọran rẹ lohun nigba ti wọn ba ki i nilọ bayii pe: “Ẹ ṣe akitiyan lati ri wipe ohun gbogbo n tẹsiwaju niwọn igba ti mo ba si le wa laaye; lẹyin ti mo ba ku, o le ri bi o ba ti ṣe fẹ.” Lasan ni a ṣe ikilọ fun atunṣe. O ri awọn iwa ibi naa, ṣugbọn ko ni igboya tabi agbara lati koju wọn. Iparun ti o n duro de France ni o ṣe alaye rẹ rẹgi ninu idahun onimẹlẹ ati ti imọ-ti-ara-ẹni-nikan ti o sọ wipe, “Lẹyin mi, igbi omi!”

Nipa ṣiṣiṣẹ lori ẹmi owu awọn ọba ati awọn ti n ṣe akoso, Romu jẹ ki wọn ti awọn eniyan mọ inu igbekun, nitori ti o mọ daradara wipe ijọba naa a di alailagbara, o si gbero wipe nipa eyi yoo le di awọn alaṣẹ ati awọn ero ilu mọ abẹ iṣakoso rẹ. Pẹlu iwoye ti o ri ọjọ iwaju o mọ wipe lati le mu awọn eniyan nigbekun daradara, a nilati de ẹwọn naa mọ ọkan wọn; nitori ọna ti o daju julọ lati maṣe jẹ ki wọn le bọyọ kuro ninu igbekun wọn ni lati maṣe jẹ ki wọn le ja fun ominira. Ọpọlọpọ ijiya ti o ju ti ara lọ ti o wá lati ara ilana rẹ ni iwa ibajẹ. A fi Bibeli dun wọn, a tun fi wọn silẹ fun ikọni lori fifi aimoye di nnkan mu ati imọ-ti-ara-ẹni nikan, awọn eniyan wa ninu aimọkan ati igbagbọ asan, wọn tẹri sinu iwa ipa, titi ti wọn ko fi le ṣe akoso ara wọn.

Ṣugbọn abayọri gbogbo iwọnyi yatọ patapata si erongba Romu. Dipo ki o jẹ ki awọn eniyan o gba ikọni rẹ ni aironu, iṣẹ rẹ yori si sisọ awọn eniyan di alaigbagbọ ati oluṣọtẹ. Wọn kọ ẹsin Romu silẹ gẹgẹ bi ète awọn alufa. Wọn ri awọn alufa gẹgẹ bi ara awọn ti n ni wọn lara. Romu ni ọlọrun kan ṣoṣo ti wọn mọ; ikọni rẹ si ni ẹsin wọn kan ṣoṣo. Wọn ri iwa wọbia ati onroro rẹ gẹgẹ bi awọn eso ohun ti Bibeli fi n kọni, wọn ko si ni ni ohun kankan ṣe pẹlu rẹ.

Romu ti fi iwa Ọlọrun ati awọn ilana rẹ han ni ọna ti ko tọ, ni akoko yii, awọn eniyan kọ Bibeli ati Ẹni ti o kọ ọ silẹ. O fẹ ki awọn eniyan o ni igbagbọ ninu awọn ikọni rẹ ni aironu nipa sisọ wipe Iwe Mimọ fi ọwọ si. Ni atako si eyi, Voltaire ati awọn akẹgbẹ rẹ kọ ọrọ Ọlọrun silẹ patapata, wọn si fọn majele aigbagbọ ka ibi gbogbo. Romu ti fi bata irin lọ awọn eniyan mọlẹ; bayii awọn eniyan ti a rẹ silẹ ti a tun fiya jẹ, ni kikọ ifiyajẹni rẹ silẹ, kọ gbogbo idanilẹkun silẹ. Wọn binu nitori arẹnijẹ ti o n dan yinrin ti wọn ti n tẹriba fun fun igba pipẹ, wọn kọ otitọ ati irọ silẹ lapapọ; wọn fi ainiwọntuwọnsi pe ominira, awọn ẹru iwa ipa n yọ nitori ohun ti wọn pe ni ominira.

Ni igba ti idoju ijọba bolẹ bẹrẹ, nipa aṣẹ ọba awọn eniyan ni aṣoju ti o ju ti apapọ awọn ijoye ati ti awọn alufa lọ. Nipasẹ eyi, agbara wa ni ọwọ wọn; ṣugbọn wọn ko ṣetan lati lo o pẹlu ọgbọn ati iwọntuwọnsi. Pẹlu itara lati ṣe atunṣe si gbogbo iya ti wọn ti jẹ, wọn pinu lati ṣe atunto ni awujọ. Awọn ero ilu ti inu n bi, ti ọkan wọn kun fun ikoro ati iranti ijiya ọjọ pipẹ, pinu lati yi ijiya inu ilu, eyi ti wọn ko le gbe mọ pada, ki wọn si gbẹsan ara wọn lara gbogbo awọn ti wọn ri gẹgẹ bi okunfa ijiya wọn. Awọn ti a n fiya jẹ lo ẹkọ ti wọn kọ ni abẹ inira, wọn wa di olufiyajẹ awọn ti n fi iya jẹ wọn.

France ti iya n jẹ n kore ohun ti o gbin ninu ẹjẹ. Ayọrisi bi o ti tẹriba fun aṣẹ Romu jẹ eyi ti o buru jọjọ. Nibi ti France gbe igi idanasunni si ni igba iṣẹ Atunṣe labẹ akoso ẹsin Romu, nibẹ naa ni idoju ijọba bolẹ gbe ero ibẹnilori rẹ akọkọ si. Ni ibi gan an pato ti a ti dana sun awọn ajẹriku akọkọ ni ọrundun kẹrindinlogun, nibẹ ni a ti bẹ awọn olujiya akọkọ lori ni ọrundun kejidinlogun. Ni kikọ iyinrere, eyi ti i ba wo o san silẹ, France ṣilẹkun silẹ fun aigbagbọ ati iparun. Nigba ti a ti kọ ikoninijanu ofin Ọlọrun silẹ, a ri wipe ofin eniyan ko tó lati da igbi ifẹkufẹ alagbara inu eniyan duro; a si ti orilẹ ede naa sinu iṣọtẹ ati idarudapọ. Biba Bibeli jagun ni o bẹrẹ akoko ti a pe ni Akoso Ẹru ninu itan aye. Alaafia ati ayọ kuro ninu ile ati ọkan awọn eniyan. Ko si ẹni ti o ni aabo. A le funra si ẹni ti n ṣẹgun loni, ki a si ṣe idalẹbi fun ni ọla. Iwa ipa ati ifẹkufẹ ara n ṣe akoso laisi idiwọ.

A fi ipa mu ọba, awọn alufa, ati awọn ijoye lati bọwọ fun iwa buburu ti awọn eniyan ti wọn ti ya were yii n wu. Bi wọn ti pa ọba

tubọ n ru ongbẹ wọn fun igbẹsan soke ni; awọn ti wọn si paṣẹ iku fun naa tẹle lọ si ibi ibẹnilori laipẹ. A ṣe ipinu lati pa gbogbo awọn ti a ba funra si wipe wọn ko fẹran idoju ijọba bolẹ naa. Awọn ọgba ẹwọn kun akunfaya, ni akoko kan, awọn bi i o le ni 200,000 ni wọn wa ninu rẹ. Awọn iṣẹlẹ ẹlẹru ni wọn kun inu awọn ilu ijọba naa. Ẹgbẹ awọn ọlọtẹ kan n tako omiran, France wa di oju ija nla fun awọn eniyan ti wọn jijọ n jijadu, awọn ti igbona ifẹkufẹ n dari. “Ni Paris rogbodiyan kan n tẹle omiran, ti gbogbo awọn olugbe inu rẹ si pin ara wọn si ẹlẹgbẹjẹgbẹ ti n jijọ n ja, ti erongba wọn ko ju ki wọn maa pa ara wọn lọ.” Lati pakun ijiya awọn eniyan, orilẹ ede naa n ba awọn orilẹ ede awọn agbara nla ni Europe ja ija alagbara ọlọjọ pipẹ. Orilẹ ede naa ti di otoṣi, awọn ọmọ ogun n beere fun owo ti wọn jẹ wọn, ebi n pa awọn ara Paris, awọn ọmọ ita ti ba awọn agbegbe jẹ, iwa ọlaju si ti fẹrẹ kasẹ nilẹ nitori iwa rogbodiyan ati iwa ainiwọntuwọnsi.”

Awọn eniyan ti kọ ẹkọ iwa ika ati ifiyajẹni ti Romu fi kọni daradara. Ọjọ igbẹsan ti de ni ikẹyin. Kii ṣe awọn ọmọlẹyin Kristi ni a n ti mọ inu tubu, ti a tun n wọ lọ si ibi isuninina ni akoko yii. O pẹ ti a ti pa wọn, tabi ti a ti le wọn lọ si ilẹ ajeji. Romu ti kii ṣaanu funni wa ni imọlara agbara buburu awọn ti o ti kọ lati ni inudidun si iṣẹ ẹjẹ. “Apẹẹrẹ inunibini ti awọn alufa France ti fihan fun ọjọ pipẹ, ni a wa n wu si wọn pẹlu agbara nla. Ibi ibẹnilori pupa foo pẹlu ẹjẹ awọn alufa. Ibi ifipa muni siṣẹ ati ọgba ẹwọn, ti awọn Huguenots fi igba kan kun inu wọn wa kun fun awọn ti n ṣe inunibini si wọn. A fi ẹwọn de wọn mọ àga ìjòkó, ti wọn si n ṣiṣẹ pẹlu obele, awọn alufa Katoliki ti Romu ni iriri gbogbo ijiya ti ijọ wu si awọn ẹlẹkọ odi oniwapẹlẹ laisi idiwọ.”

“Lẹyin eyi ni akoko ile igbẹjọ ti o buru julọ, ti o lo awọn ofin ti wọn buru julọ; nigba ti eniyan ko le ki alabagbe rẹ, tabi gba adura . . . laisi ewu wipe o le di ọran nla; nigba ti awọn amí wa ni ibi gbogbo; nigba ti ibi ibẹnilori n ji ṣiṣẹ laraaro; nigba ti ọgba ẹwọn kun fọfọ bi awọn ọkọ ti a fi n ko awọn ẹru; nigba ti awọn ibi ti omi n gba san kọja n san fun ẹjẹ lọ si odo Seine. . . . Nigba ti ọkọ n ko awọn ti wọn jẹbi gba aarin igboro Paris kọja lojoojumọ lọ si ibi iparun wọn, awọn alaṣẹ ti igbimọ aṣejọba ran lọ si awọn ẹka ile iṣẹ n yọ ninu iwa ika ti o buru jai eyi ti a ko mọ ninu olu ilu. Ọbẹ ẹrọ ti a fi n pani ko yara to fun iṣẹ ipaniyan wọn. A fi ibọn pa ọpọlọpọ awọn eniyan miran. A da iho lu si abẹ ọkọ oju omi ti a ko ọpọlọpọ eniyan si. Ilu Lyons di aṣalẹ. Ni ilu Arras, a ko ṣe aanu buburu ti iku ti o yá kankan fun awọn ẹlẹwọn. Titi de Loire, lati Saumur titi de okun, ọpọ awọn eyẹ lorişirişi ni wọn n jẹ awọn oku ti wọn wa ni ihoho, ti a fi okun so pọ lọna to banilẹru. A ko fi aanu han fun ọkunrin tabi obinrin, ọmọde tabi agba. Iye awọn ọdọmọkunrin ati ọdọmọbinrin ti ọjọ ori wọn to ọmọ

ọdun mẹtadinlogun ti ijọba buburu naa pa ni a o maa ka iye wọn ni ọgọrọọrun. A ja awọn ọmọ jojolo gba kuro ni ọyan iya wọn, ti a si n sọ wọn lati ori ọkọ kan de ikeji laarin awọn ọmọ ẹgbẹ Jacobin." Laarin ọdun mẹwa pere, ọgọọrọ awọn eniyan ni wọn ṣegbe.

Gbogbo iwọnyi ṣẹlẹ gẹgẹ bi Satani ti fẹ. Ohun ti o ti n ṣiṣẹ fun ọdun pipẹ lati ri niyii. Ẹtan ni ilana rẹ lati ibẹrẹ titi de opin, erongba kan ṣoṣo ti o ni si ni lati ko ewu ati ijiya ba eniyan, lati ba iṣẹ Ọlọrun jẹ, ki o si mu kuro, lati ba erongba aanu ati ifẹ Ọlọrun jẹ, ki o si fa ibanujẹ ni ọrun. Nipasẹ ọgbọn ẹwẹ itanjẹ rẹ, o fọ awọn eniyan loju, yoo si jẹ ki wọn da Ọlọrun lẹbi nitori iṣẹ rẹ wọnyi, afi bi ẹnipe gbogbo ijiya wọnyi jẹ abayọri eto Ẹlẹda. Ni ọna kan naa, nigba ti awọn ti o fi agbara rẹ rẹ silẹ ti o tun fiyajẹ ba ri ominira wọn, o n dari wọn lati ṣe aṣeju ati lati wuwa buburu. Awọn onroro ati afiyajẹni a wa na ọwọ si iṣẹlẹ aileko-ara-ẹni-nijanu yii gẹgẹ bi apẹẹrẹ ayọrisi ominira.

Nigba ti a ba da irọ kan mọ ninu iboju kan, Satani a tun fun ni iboju miran, awọn eniyan a si fi itara gba a bii ti iṣaaju. Nigba ti awọn eniyan ri ẹsin Romu gẹgẹ bi ẹtan, ti ko si le lo awọn iranṣẹ rẹ lati jẹ ki wọn o tẹ ofin Ọlọrun loju, o dari wọn lati jẹ ki wọn ri gbogbo ẹsin gẹgẹ bi itanjẹ, ati Bibeli gẹgẹ bi itan arosọ; ati ni kikọ aṣẹ mimọ silẹ, wọn fi ara wọn silẹ fun ẹṣẹ patapata. Aṣiṣe nla ti o mu ewu yii wa si ori awọn olugbe France ni bi wọn ti se kọ otitọ nla kan yii silẹ: wipe inu ifofinde ofin Ọlọrun ni ominira tootọ wa. "Ibaṣepe iwọ fi eti si ofin Mi! nigba naa ni alaafia rẹ iba da bi odò, ati òdodo rẹ bi igbi omi okun." "Alaafia ko si fun awọn eniyan buburu, ni Oluwa wi." "Ṣugbọn ẹni ti o ba fi eti si Mi yoo maa gbe ni ailewu, yoo si fi ara balẹ kuro ninu ibẹru ibi." Aisaya 48:18, 22; Owe 1:33.

Awọn ti ko gbagbọ ninu iwalaaye Ọlọrun, awọn alaigbagbọ, ati awọn afaseyin tako ofin Ọlọrun, wọn si kọ ọ silẹ; ṣugbọn ayọrisi ipa wọn fihan wipe wiwa ni alaafia eniyan so pọ mọ ṣiṣe igbọran si ilana Ọlọrun. A rọ gbogbo awọn ti ko ni ka ẹkọ lati inu iwe Ọlọrun lati ka a ninu itan awọn orilẹ ede.

Nigba ti Satani n ṣiṣẹ nipasẹ ijọ Romu lati maṣe jẹ ki awọn eniyan o ṣe igbọran, o fi ero rẹ pamọ, o si fi iboju bo iṣẹ rẹ debi pe a ko ri irẹsilẹ ati ijiya ti o tẹle gẹgẹ bi eso ẹṣẹ. Ẹmi Ọlọrun si ni o n di agbara rẹ lọwọ ti ko fi jẹ ki erongba rẹ o wa si imuṣẹ patapata. Awọn eniyan ko le tọ ipasẹ ayọrisi naa de ibẹrẹ rẹ ki wọn si ri okunfa ijiya wọn. Ṣugbọn ninu idoju ijọba bolẹ, ile igbimọ aṣofin apapọ kọ ofin Ọlọrun silẹ patapata. Ninu Iṣakoso Ibẹru ti o tẹle, gbogbo eniyan ni wọn le ri iṣọwọṣiṣẹ okunfa ati ayọrisi naa.

Nigba ti France kọ Ọlọrun silẹ ni gbangba, ti o kọ Bibeli silẹ, awọn eniyan buburu ati ẹmi okunkun yọ nitori bi wọn ti ṣe ri ohun ti wọn

ti n wa fun igba pipẹ—ijọba ti ko ni ni ikalọwọko ofin Ọlọrun. Nitori ti a ko tete ṣe idajọ si iṣẹ buburu, ọkan awọn ọmọ eniyan “pinu ninu wọn lati ṣe ibi.” Oniwasu 8:11. Ṣugbọn riru ofin pipe ati ofin ododo gbọdọ yori si ijiya ati iparun ni. Bi o tilẹ jẹ wipe a ko ṣe idajọ rẹ lọgan, iwa buburu eniyan yoo ṣiṣẹ iparun wọn dandan ni. Iwa ifaseyin ati iwa ọdaran ti a ti n wu fun ọpọ ọdun ti n ko ara wọn jọ pọ fun ibinu di ọjọ igbẹsan; nigba ti iwa ẹṣẹ wọn kun, o ti pẹ ju ki awọn ti wọn gan Ọlọrun to mọ wipe ohun ti o lẹru ni lati da suuru Ọlọrun lagara. A mu Ẹmi Ọlọrun ti n kani lọwọ ko, ti o n di agbara buburu Satani lọwọ, kuro pupọpupọ, a si gba ẹni ti o jẹ wipe idunnu rẹ kan ṣoṣo ni ijiya eniyan laaye lati ṣe iṣẹ rẹ bi o ti fẹ. A fi awọn ti wọn yan iṣẹ iṣọtẹ silẹ lati ka eso rẹ titi ti ilẹ naa fi kun fun iwa ọdaran ti wọn buru ju eyi ti a le kọ silẹ lọ. A gbọ igbe—igbe ibanujẹ kikoro—lati awọn agbegbe ti a ti sọ di ahoro ati ilẹ ti a ti parun. Ẹsin, ofin, alaafia awujọ, idile, ilu ati ijọ—gbogbo wọn ni ọwọ aimọ ti a gbe si ofin Ọlọrun bi lulẹ. Ọkunrin ọlọgbọn naa sọ nitootọ wipe: “Eniyan buburu yoo ṣubu ninu iwa buburu rẹ.” “Bi ẹlẹṣẹ tilẹ ṣe ibi ni igba ọgọrun, ti ọjọ rẹ si gun, ṣugbọn nitootọ emi mọ wipe yoo dara fun awọn ti wọn bẹru Ọlọrun, ti wọn wariri niwaju Rẹ: ṣugbọn ki yoo dara fun eniyan buburu.”

Owe 11:5; Oniwaasu 8:12, 13. “Wọn korira imọ, wọn ko yan ibẹru Oluwa;” “nitori naa, wọn yoo jẹ ninu eso ọna wọn, wọn o si kun fun ète ara wọn.” Owe 1:29, 31.

Awọn ẹlẹri tootọ fun Ọlọrun, ti agbara asọrọ odi ti o “jade wa lati inu ọgbun ainisalẹ” pa, ko ni dakẹ jẹẹ fun igba pipẹ. “Lẹyin ọjọ mẹta ati aabọ, Ẹmi iye lati ọdọ Ọlọrun wọ inu wọn, wọn si duro lori ẹsẹ wọn; ẹru nla si ba gbogbo awọn ti wọn ri wọn.” Ifihan 11:11. Ni ọdun 1793 ni igbimọ France fi ọwọ si ofin ti o pa ẹsin Kristẹni rẹ, ti o si kọ Bibeli silẹ. Ọdun mẹta ati aabọ lẹyin eyi, igbimọ yii kan naa pa aṣẹ ti o yi ofin yii pada, o si fi aaye gba Iwe Mimọ. Araye n woran pẹlu iyalẹnu si iru ẹbi ti o jẹyọ latari kikọ Ọrọ Mimọ silẹ, awọn eniyan si mọ bi o ti ṣe pataki tó lati ni igbagbọ ninu Ọlọrun ati ọrọ Rẹ gẹgẹ bi ipilẹ fun iwa rere ati iwa ọmọluabi. Oluwa wipe: “Tani iwọ kẹgan, ti o si sọrọ buruku si? tani iwọ si gbe oju rẹ ga si, ti o si gbe ohun rẹ soke gangan? si Ẹni Mimọ Israeli.” Aisaya 37:23. “Nitori naa sa wo o, Emi o mu ki wọn mọ lẹẹkan yii, Emi o si mu ki wọn mọ ọwọ Mi ati ipa Mi; wọn o si mọ wipe orukọ Mi ni Jehofa.” Jeremaya 16:21.

Nipa awọn ẹlẹri naa, woli naa tẹsiwaju lati sọ wipe: “Wọn si gbọ ohun nla lati ọrun ti o n sọ fun wọn wipe, Ẹ goke wa sihin. Wọn si goke lọ si ọrun ninu ikuuku awọsanma; awọn ọta wọn si kiyesi wọn.” Ifihan 11:12. Lati akoko ti France ti ba ẹlẹri Ọlọrun mejeeji jagun, a bu ọla fun wọn ju bi a ti ṣe tẹlẹ ri lọ. Ni 1804, a da British ati Foreign Bible

Society silẹ. Awọn ẹgbẹ miran ti wọn fi ara jọ ọ tẹle, pẹlu ọpọlọpọ ẹka ni orilẹ ede Europe. Ni 1816, a da American Bible Society silẹ. Nigba ti a da British Society silẹ, aadọta ede ni a fi tẹ Bibeli sita. Lati igba naa lọ, a ti ṣe itumọ rẹ ni ọpọlọpọ ede.

Fun aadọta ọdun ṣaaju 1792, a ko kọbiara si iṣẹ iranṣẹ ni ilẹ okeere. A ko da ẹgbẹ tuntun silẹ, awọn ijọ perete si ni wọn n ṣa ipa lati tan ẹsin Kristẹni ka ilẹ awọn abọrisa. Ṣugbọn bi ọrundun kejidinlogun ti n lọ si opin, ayipada nla ṣẹlẹ. Abayọri iṣọwọronu eniyan ko tẹ wọn lọrun mọ wọn ri wipe wọn nilo ifihan Ọlọrun ati ẹsin ti o jade lati inu wa. Lati akoko yii, iṣẹ ilẹ okeere dagba ni ọna ti ko gba ṣẹlẹ ri.

Idagbasoke ninu iṣẹ itẹwe fun iṣẹ pinpin Bibeli kiri lagbara. Awọn ohun elo ibara ẹni sọrọ laarin awọn orilẹ ede ti o pọ si, wíwó idiwọ aimọkan ati idanikanwa gẹgẹ bi orilẹ ede ati bi popu Romu ti ṣe padanu agbara oṣelu ṣi ọna silẹ lati jẹ ki ọrọ Ọlọrun wọle. Fun ọdun diẹ, a ta Bibeli laarin igboro Romu laisi idiwọ, bayi, a ti gbe de ibi gbogbo ti eniyan n gbe lori ilẹ aye.

Voltaire alaigbagbọ fi igba kan fọnnu wipe: “O su mi lati gbọ bi awọn eniyan ti n tẹnumọ wipe awọn ọkunrin mejila ni wọn da ẹsin Kristeni silẹ. Maa fi daniloju wipe ẹnikan ṣoṣo le doju rẹ bolẹ.” Ọpọ iran ni wọn ti kọja lẹyin iku rẹ. Ọgọọrọ awọn eniyan si ni wọn darapọ mọ awọn ti n ba Bibeli jagun. Ṣugbọn dipo ki a pa run, nibi ti ọgọrun wa ni akoko Voltaire, ẹgbẹrun mẹwa, ani ẹgbẹrun lọna ẹgbẹrun lọna ẹgbẹrun ẹda iwe Ọlọrun ni wọn wa. Ninu ọrọ Alatunṣe iṣaaju nipa ijọ Kristẹni, “Bibeli jẹ irin alagbẹdẹ ti o ti lo ọpọlọpọ òòlù gbó.” Oluwa wipe: “Ko si ohun ija ti a ṣe lodi si ọ ti yoo ṣe deede; gbogbo ahọn ti o ba dide si ọ ni idajọ ni iwọ yoo da lẹbi.” Aisaya 54:17 “Ọrọ Ọlọrun yoo wa titi lae.” “Gbogbo aṣẹ Rẹ daju. Wọn duro gbọin titi lae, a si ṣe wọn ninu otitọ ati ododo.” Aisaya 40:8; O. Dafidi 111:7,8. Ohunkohun ti a ba kọ si ori aṣẹ eniyan yoo bi wo; ṣugbọn eyi ti a ba pilẹ rẹ si ori apata ọrọ Ọlọrun ti ko le yipada yoo duro titi lae.

16

Awọn Baba Arinrin-Ajo

Nigbati awọn Alatunṣe England n kọ ẹkọ Romu silẹ, wọn di ọpọlọpọ awọn iṣesi rẹ mu. Bi o tilẹ jẹ wipe wọn kọ aṣẹ Romu silẹ, ki i ṣe diẹ ninu awọn aṣa ati iṣesi rẹ ni wọn ko wọ inu ijọsin ijọ England. A sọ wipe awọn nnkan wọnyi ko ni i ṣe pẹlu ẹri ọkan; ati pe bi o tilẹ jẹ wipe Iwe Mimọ ko pa wọn laṣẹ, nitori naa wọn ko ṣe pataki tobẹẹ, ati nitori pe a ko tako wọn, wọn ko lewu. Siṣe awọn nnkan wọnyi jẹ ki ọgbun ti o pin awọn ijọ ti a fọ mọ ati Romu niya o kere si, wọn si sọ wipe wọn n jẹ ki awọn atẹle Romu o gba igbagbọ Protestant.

Si awọn ti ko fẹ ayipada ti wọn si n fẹ ibarẹ, o dabi ẹnipe iṣọwọronu yii muna doko. Ṣugbọn awọn kan wa ti wọn ko ronu bẹẹ. Wipe awọn aṣa wọnyi "le di ọgbun ti o wa laarin Romu ati iṣẹ Atunṣe" jẹ idi kan ti o lagbara lati fi kọ wọn silẹ. Wọn ri wọn gẹgẹ bi ami ẹru ninu eyi ti a ti gba wọn silẹ ti wọn ko si ni ero lati pada sinu rẹ. Wọn ronu wipe Ọlọrun ti gbe awọn ilana ti wọn n dari ijọsin Rẹ kalẹ sinu ọrọ Rẹ, ati pe awọn eniyan ko ni ominira lati fikun wọn tabi yọ kuro ninu wọn. Ohun ti o fa iyapa nla ti akọkọ ni wiwa ọna lati fi aṣẹ ijọ ran ti Ọlọrun lọwọ. Romu bẹrẹ nipa pipaṣẹ ohun ti Ọlọrun ko tako, o pari rẹ si titako ohun ti Ọlọrun palaṣẹ.

Ọpọ ni wọn fi tọkantọkan fẹ ki a pada si iwa mimọ ati ailabula ti wọn wa ninu ijọ akọkọ. Wọn ri ọpọlọpọ awọn aṣa ijọ ilẹ Gẹẹsi gẹgẹ bi ohun iranti ẹsin iborisa, ẹri ọkan wọn ko si le jẹ ki wọn darapọ mọ ijọsin rẹ. Ṣugbọn nitori pe aṣẹ ilu n ti ijọ lẹyin, ko fi aaye gba ki ẹnikẹni o yapa kuro ninu ilana rẹ. Ofin pa a laṣẹ pe ki a kopa ninu ijọsin rẹ, a ko si fi aaye gba ipejọpọ fun ijọsin ti a ko ba pa laṣẹ, pẹlu ijiya lilọ si ọgba ẹwọn, kikuro ni ilu, ati iku.

Ni ibẹrẹ ọrundun kẹtadinlogun, ọba ti o ṣẹṣẹ gun ori itẹ England sọ wipe oun ti pinu lati mu ki awọn Puritans “o dabi awọn toku, tabi . . . ki wọn o da wọn lagara titi ti wọn a fi kuro lori ilẹ naa, tabi ohun ti o buru ju eyi lọ.” A dọdẹ wọn, a ṣe inunibini si wọn, a tun ti wọn mọle, wọn ko ri aami fun akoko rere ni ọjọ iwaju, ọpọlọpọ wa gbagbọ wipe, fun awọn ti wọn ba fẹ sin Ọlọrun gẹgẹ bi ẹri ọkan wọn ba ti sọ ọ, “England ko le jẹ ibugbe fun wọn mọ lae.” Ni ikẹyin awọn miran pinu lati wa aabo ni Holland. Wọn doju kọ iṣoro, adanu, ati ọgba ẹwọn. Erongba wọn ko wa si imuṣẹ. Ṣugbọn iforiti pẹlu iduroṣinṣin ṣẹgun nikẹyin, wọn ri aabo ni orilẹ ede Dutch.

Nigba ti wọn n sa kiri, wọn fi ile wọn, ẹru wọn, ati ọna ati ri onjẹ oojọ wọn silẹ. Wọn di ajeji ni ilẹ miran, laarin awọn eniyan ti n sọ ede miran, ti wọn tun ni aṣa miran. O di dandan fun wọn lati wa iṣẹ tuntun ti wọn ko ṣe ri lati le ri onjẹ jẹ. Awọn ti wọn ti fi idaji ọjọ aye wọn ro oko, wa nilati lọ kọ iṣẹ ọwọ. Ṣugbọn wọn fi tayọtayọ gba ipo naa, wọn ko fi akoko ṣofo laiṣiṣẹ tabi ṣe irahun. Bi o tilẹ jẹ wipe àìní n ba wọn fínra, wọn dupẹ lọwọ Ọlọrun fun ibukun ti wọn si n ri gba wọn tun ri ayọ nitori pe wọn le ṣe ijọsin laisi idiwọ. “Wọn mọ wipe arinrin-ajo ni wọn, wọn ko si tẹjumọ awọn nnkan wọnyẹn, ṣugbọn wọn gbe oju wọn si oke ọrun, ilu ti wọn fẹran julọ, ọkan wọn si balẹ.”

Lẹyin odi ati ninu inira, ifẹ ati igbagbọ wọn tubọ n lokun si ni. Wọn gbẹkẹle ileri Ọlọrun, ko si bà wọn kù ni akoko aini wọn. Angẹli Rẹ wà ni ẹba wọn lati mu wọn lọkan le ati lati ran wọn lọwọ. Nigba ti o si dabi ẹnipe ọwọ Ọlọrun n tọka wọn si ikọja okun, si ilẹ ti wọn ti le ri aaye fun ara wọn, ti wọn a le fun awọn ọmọ wọn ni ominira ẹsin ti o ṣe iyebiye gẹgẹ bi ohun ajogunba, wọn tẹsiwaju laibẹru si oju ọna aanu Ọlọrun.

Ọlọrun gba wahala laaye lati ba awọn eniyan Rẹ lati le pese wọn silẹ lati le ṣe ohun agbayanu ti O fẹ fun wọn. A rẹ ijọ silẹ, ki a baa le gbe e ga. Ọlọrun fẹ fi agbara Rẹ han nitori wọn, lati le fun araye ni ẹri miran wipe Oun ko ni kọ awọn ti wọn ba gbẹkẹle Oun silẹ. O ṣe ohun gbogbo lati jẹ ki ibinu Satani ati ète awọn eniyan buburu o jasi igbega ogo Rẹ ati lati le kó awọn eniyan Rẹ wa si ibi aabo. Inunibini ati ileni kuro ni ilu n pese ọna silẹ fun ominira.

Nigba ti a kọkọ fi ipa mu wọn lati yapa kuro ninu ijọ England, awọn Puritan ti jẹ ẹjẹ ọlọwọ, gẹgẹ bi ẹni ominira Oluwa, “lati rin papọ ninu gbogbo ọna Rẹ ti a fi han wọn tabi ti a yoo fi han wọn.” Eyi gan an ni ẹmi iṣẹ atunṣe nitootọ, ẹkọ ti o ṣe pataki ninu ẹsin Protestant. Pẹlu erongba yii ni awọn Arinrin-ajo fi kuro ni Holland lati wa ilé ni Amerika. John Robinson, alufa wọn, ti iṣọwọṣiṣẹ Ọlọrun ko jẹ ki o tẹle wọn lọ sọ fun awọn arinrinajo wọnyi ninu ọrọ odigboṣe rẹ wipe:

“Ẹyin ará, laipẹ a yoo pinya, Oluwa si mọ boya maa tun ri oju yin lẹẹkan si. Ṣugbọn boya Oluwa fi aaye gba a tabi ko fi aaye gba a, mo rọ yin niwaju Ọlọrun ati awọn angẹli alabunkun Rẹ lati maṣe tẹle mi ju bi mo ba ti ṣe tẹle Kristi lọ. Bi Ọlọrun yoo ba fi ohun miran han fun yin nipasẹ ohun èlò Rẹ miran, ẹ ṣetan lati gba a, gẹgẹ bi ẹ ti ṣetan lati gba otitọ ninu iṣẹ iranṣẹ mi; nitori ti o damiloju wipe Oluwa ní awọn otitọ miran ati imọlẹ ti koi ti bú jade lati inu ọrọ mimọ Rẹ wá.”

“Ni ipa ti emi, mi o le sọkun fun ipo awọn ijọ ti a fọ mọ tó, awọn ti wọn ti de gbedeke kan ninu ẹsin, ti wọn ko si ni lọ kọja ohun elo ti a fi ṣe atunṣe wọn. A ko le mu awọn atẹle Luther lọ kọja ohun ti Luther ri; . . . ẹ ri awọn atẹle Calvin, wọn duro gbọin si ibi ti eniyan nla Ọlọrun naa fi wọn silẹ si, sibẹ ko ri ohun gbogbo. A nilati ṣe ikaanu fun iwa oṣi yii gidigidi; nitori pe bi o tilẹ jẹ wipe wọn jẹ ina ti n jo ti o si n tan ni akoko wọn, sibẹ, wọn ko wọ inu gbogbo imọran Ọlọrun, ṣugbọn bi o ba jẹ wipe wọn si wa laaye ni, wọn i ba fẹ lati gba imọlẹ miran gẹgẹ bi eyi ti wọn kọkọ gba.”

“Ẹ ranti ẹjẹ ijọ yin, ninu eyi ti ẹ ti fi ohùn ṣọkan lati rin ninu gbogbo ọna Oluwa, ti a fi han yin, tabi ti a o fi han yin. Ẹ ranti lati pa ileri ati ẹjẹ yin mọ pẹlu Ọlọrun ati ara yin, lati gba imọlẹ ati otitọ ti a o fi han fun yin ninu ọrọ Rẹ ti a kọ silẹ; ṣugbọn ju gbogbo rẹ lọ, mo bẹ yin, ẹ ṣọra fun ohun ti ẹ o gba gẹgẹ bi otitọ, ki ẹ ṣe afiwe rẹ pẹlu awọn iwe otitọ ki ẹ to gba a; nitori ko ṣe e ṣe ki awọn Kristẹni ti wọn ṣẹṣẹ ti inu iru okunkun dudu ti o tako ilana Kristẹni yẹn jade, ki imọ ti o peye ni kikun o si bu yọ lẹẹkan naa.”

Ifẹ fun ominira ẹri ọkan ni o jẹ ki awọn Arinrin-ajo o doju kọ wahala irinajo gigun la okun ja, lati fi ara da iṣoro ati ewu inu aginju, ati pẹlu ibukun Ọlọrun, lati fi ipilẹ orilẹ ede nla lelẹ si ilẹ Amẹrika. Sibẹ pẹlu bi wọn ti jẹ olootọ ti wọn si bẹru Ọlọrun to, awọn Arinrin-ajo koi tii ni oye nipa ikọni ti ominira ti ẹsin. Wọn ko ṣetan lati fun awọn miran ni ominira ti wọn padanu ohun pupọ lati ri gba. “Perete, ani awọn ti wọn jẹ ọga ninu ironu ati iwuwasi ni ọrundun kẹtadinlogun ni wọn ni oye kiun nipa ẹkọ nla yii, eyi ti o jẹ jade lati inu Majẹmu Tuntun wa, ti o ri Ọlọrun gẹgẹ bi onidajọ kan ṣoṣo lori igbagbọ eniyan.” Ikọni wipe Ọlọrun ti fun ijọ ni ẹtọ lati ṣe akoso ẹri ọkan, ati lati ṣe itumọ ẹkọ odi ki o si fiya jẹ ẹ, jẹ ọkan lara eyi ti o jinlẹ julọ ninu awọn aṣiṣe ijọ padi. Nigba ti awọn Alatunṣe kọ ikọni Romu silẹ, ẹmi ainifarada rẹ ko kuro lara wọn tan. Okunkun nla ti ẹsin popu fi bo gbogbo ẹsin Kristẹni fun ọpọ ọdun ti o fi ṣe akoso koi tii kuro tan patapata. Ọkan lara awọn ọga ninu iṣẹ alufa ni Massachusetts Bay sọ wipe: “Ifarada ni o jẹ ki aye o tako ẹsin Kristẹni; ijọ ko si wu iwa buburu nipa fifi iya jẹ awọn ẹlẹkọ odi.” Awọn ti wọn tẹdo ṣe ofin wipe awọn ọmọ ijọ nikan ni wọn

le dasi ọrọ oṣelu. A dá eyi ti o dabi ijọ ilu silẹ, a fẹ ki gbogbo eniyan o san owo lati ran awọn alufa lọwọ, a si fun awọn alaṣẹ ilu ni aṣẹ lati tẹ ẹkọ odi rì. Nipa eyi agbara oṣelu wa lọwọ ijọ. Ko pẹ pupọ ti awọn ilana wọnyi jade si abayọri ti a ko le fẹku — inunibini.

Ọdun mọkanla lẹyin ti a da ibudo akọkọ silẹ, Roger Williams wa si Ilẹ Tuntun naa. Bi i ti awọn Arinrin-ajo akọkọ, o wá lati wa je igbadun ominira ẹsin; ṣugbọn ni iyatọ si wọn, o ri—ohun ti iwọnba perete awọn eniyan ni akoko rẹ ri—wipe ominira je ẹtọ fun gbogbo eniyan eyi ti a ko le gba kuro, ohunkohun ti wọn i ba a gbagbọ. O je ẹni ti n fi tọkantọkan wa otitọ, o gba pẹlu Robinson wipe ko ṣe e ṣe ki a ti gba gbogbo imọlẹ lati inu ọrọ Ọlọrun tan. Williams "ni ẹni akọkọ ni igba ọlaju Kristẹni lati dá ijọba silẹ lori ikọni ominira ti ẹri ọkan, ati ibadọgba gbogbo igbagbọ niwaju ofin." O sọ wipe ojuṣe awọn alaṣẹ ilu ni lati dena iwa ọdaran, ṣugbọn ki i ṣe lati ṣe idari ẹri ọkan. O sọ wipe, "Awọn ara ilu tabi awọn alaṣẹ le ṣe pinu lori ohun ti o yẹ eniyan si ara wọn; ṣugbọn nigba ti wọn ba n ṣe akitiyan lati ṣe alaye lori ojuṣe eniyan si Ọlọrun, wọn n kọja aye wọn, ko si le si aabo; nitori pe o han kedere wipe bi alaṣẹ ba ni agbara, o le pa aṣẹ awọn ilana igbagbọ kan loni, ki o tun pa omiran lọla; ati bi a si ti ṣe ri ni England labẹ orişirişi awọn ọba ati ọbabinrin, ati orişirişi popu ati igbimọ ninu ijọ Romu; ti o fi je wipe igbagbọ a wa di idarudapọ nla."

A ṣe ofin wipe ki gbogbo eniyan o pejọpọ fun ijọsin bi wọn ko ba fẹ jiya sisan owo itanran tabi itimọle. "Williams tako ofin naa; ofin ti o buru julọ ni England ni eyi ti o kan an nipa fun awọn eniyan lati jọsin ninu ile ijọsin. O ri fifi ipa mu awọn eniyan ti igbagbọ wọn yatọ lati parapọ gẹgẹ bi titẹ ẹtọ wọn loju; lati wọ eniti ko gbagbọ ninu ẹsin, ati ẹni ti ko nifẹ si wa sinu isin tumọ si wipe wọn n fẹ agabagebe. . . . O sọ pe, 'A ko gbọdọ fi ipa mu ẹnikẹni lati jọsin, tabi ki o ṣe atilẹyin ijọsin kan ni atako si ero ọkan rẹ.' Awọn alatako kigbe pẹlu iyalẹnu si ikọni rẹ wipe, 'Kini! ṣe alagbaṣe ko to fun iṣẹ ọya rẹ ni?' O dahun wipe, 'Bẹẹni, ṣugbọn fun ẹni ti o ya a.'"

Wọn bọwọ fun Roger Wiliams, wọn si fẹran rẹ gẹgẹ bi alufa olootọ, ẹni ti o ni ẹbun ti o ṣọwọn, ti işotitọ rẹ kii yẹ, ti o si ni ẹmi aanu tootọ; sibẹ a ko le fi ara da bi o ti fi iduroşinşin tako ẹtọ awọn alaṣẹ ilu lati ṣe akoso lori ijọ, ati bi o ti n beere fun ominira ẹsin. Wọn sọ wipe, lilo ikọni tuntun yii yoo "bi ipilẹ ilu ati ijọba orilẹ ede naa wo." A ṣe idajọ fun wipe ki o kuro ni awọn ibudo naa, ki a ma baa ti i mọle, o salọ nikẹyin ninu otutu ati atẹgun igba yinyin, o lọ sinu igbo kìjikìji.

O sọ wipe, "Fun osẹ mẹrinla, a ti mi kaakiri kikankikan ninu akoko kikoro, laimọ ohun ti a n pe ni ounjẹ tabi ibusun." Ṣugbọn "awọn ẹyẹ oju ọrun fun mi ni ounjẹ ninu aginju," iho inu igi si je ibugbe fun mi.

Bayi ni o ṣe tẹsiwaju ninu irinajo rẹ gba inu yinyin ati igbo ti ko ni ipasẹ kọja titi ti o fi ri aabo pẹlu ẹya awọn Indian kan ti wọn fi ọkan tan an, ti wọn si fẹran rẹ, nigba ti oun n ṣa ipa lati kọ wọn ni awọn otitọ iyinrere.

Ni ikẹyin o rin de bebe Narragansett Bay lẹyin ọpọ oṣu ninu irinkiri ati iyipada, nibẹ o ṣe ipilẹ ijọba akọkọ ni akoko ọlaju ti yoo funni ni ominira ẹsin nikikun. Ipilẹ igbagbọ ibudo Roger Williams ni wipe, "gbogbo eniyan ni o yẹ ki o ni ominira lati sin Ọlọrun gẹgẹ bi imọlẹ inu ọkan wọn." Ipinlẹ kekere rẹ, Rhode Island, di ibi aabo fun awọn ti a n ni lara, o si n pọ si, o si n ṣe rere titi ti igbagbọ ipilẹ rẹ—ominira oṣelu ati ẹsin—fi di okuta igun ile orilẹ ede Amẹrika.

Ninu iwe atijọ pataki nì eyi ti awọn baba nla wa gbe kalẹ gẹgẹ bi iwe ẹtọ wọn—Ikede Ominira—wọn sọ wipe: "A gba wipe awọn otitọ wọnyi fi ara han funra wọn, wipe, a da gbogbo eniyan dọgba; wipe Ẹlẹda wọn fun wọn ni awọn ẹtọ kan ti a ko le gba kuro lọwọ wọn; wipe lara wọn ni ẹmi, ominira ati ilepa idunnu wa." Iwe iṣejọba, ni ọna ti o han kedere julọ fihan wipe a ko gbọdọ fi ipa mu ẹri ọkan eniyan: "A ko nilo ayẹwo ẹsin gẹgẹ bi odiwọn fun ipo ijọba ni United States." "Ile igbimọ aṣofin ko gbọdọ ṣe ofin lati da ẹsin silẹ tabi lati tako ṣiṣe ẹsin kankan."

"Awọn ti wọn kọ iwe iṣejọba mọ ipilẹ ẹkọ ayeraye nì wipe ibaṣepọ eniyan pẹlu Ọlọrun ga ju ofin eniyan lọ, ati pe a ko le gba awọn ẹtọ rẹ si ẹri ọkan rẹ kuro. A ko nilo ironu lati fi idi otitọ yii mulẹ; a ni imọ rẹ ninu ookan aya wa. Imọlara yii, eyi ti o pe awọn ofin eniyan nija, ni o fun ọpọlọpọ awọn ajẹriku lokun ninu ijiya ati ina. Wọn ri wipe ojuṣe wọn si Ọlọrun ga ju ofin eniyan lọ, ati wipe eniyan ko le lo aṣẹ lori ẹri ọkan wọn. O jẹ ikọni ti a bi ni mọ ti ohunkohun ko le mu kuro."

Bi iroyin ti tan ka awọn orilẹ ede Europe nipa ilẹ kan ti gbogbo eniyan a ti jẹ igbadun eso iṣẹ ọwọ rẹ, ti yoo si ṣe igbọran si ẹri ọkan ara rẹ, ẹgbẹlẹgbẹ ni wọn ṣi lọ si Ilẹ Tuntun naa. Awọn ibudo yara pọ kiakia. "Pẹlu ofin pataki, Massachusetts gba awọn Kristẹni lati orilẹ ede yoo wu ki o ti wa wọle lọfẹ, ti wọn ba sá kọja okun Atlantic lati sa kuro lọwọ ogun tabi ìyàn, tabi inilara awọn oninunibini wọn.' O tun fun wọn ni iranlọwọ lati inu owo ilu. Bayi ni awọn ti a le kuro ni ilu ati awọn ẹni itẹmọlẹ ṣe di alejo agbajọpọ ilu latari ofin." Ni aarin ogun ọdun ti a kọkọ tẹdo si Plymouth, ẹgbẹẹgbẹrun awọn arinrin-ajo ni wọn tẹdo si New England.

Lati le ri ohun ti wọn n wa, "o tẹ wọn lọrun lati ri onjẹ oojọ ranpẹ jẹ pẹlu igbesi aye wahala ati aini. Wọn ko beere ohunkohun lọwọ ilẹ ayafi èrè iṣẹ wọn, eyi ti o si bojumu. Wọn ko jẹ ki ìran ologo kan o mu imọlẹ atanniję kan wa si ọna wọn. . . . Wọn jẹ ki itẹsiwaju agbegbe

wọn ti ko yara kankan ṣugbọn ti o n yatọ lojoojumọ o tẹ wọn lọrun. Wọn fi suuru fi ara da aini inu aginju, ti wọn si n bu omi rin igi ominira pẹlu omije ati oogun oju wọn, titi ti o fi fi gbongbo mulẹ."

Wọn gba Bibeli gẹgẹ bi ipilẹ igbagbọ, orisun ọgbọn ati iwe adehun ominira. Wọn n fi tọkantọkan kọ awọn ikọni rẹ ninu ile, ninu ile ẹkọ, ati ninu ijọ, ti awọn eso rẹ si n fi ara han ninu iṣọwona, oye, iwa mimọ, ati iwọntuwọnsi. Eniyan le gbe ni ibudo awọn Puritans fun ọpọ ọdun ki, "o ma ri ọmuti, tabi gbọ ki a bura, tabi ki o pade oníbárà." A fihan wipe awọn ikọni Bibeli ni aabo ti o dara julọ fun igbega orilẹ ede. Awọn ibudo ti ko lagbara tabi ti wọn danikan wà parapọ lati di ilu alagbara kan, ti o si jẹ iyalẹnu fun araye lati ri alaafia ati ọrọ "ijọ laisi popu, ati ilu laisi ọba."

Ṣugbọn ni igba gbogbo ni ọpọ eniyan n wa si ilẹ Amerika ti erongba wọn yatọ patapata si ti awọn Arinrin-ajo akọkọ. Bi o tilẹ jẹ wipe igbagbọ akọkọ ati iwa mimọ ní ipa ti o pọ, ti o si lagbara, sibẹ ipa rẹ tubọ n kere si ni bi iye awọn ti wọn n wa nitori ọrọ aye nikan ṣe tubọ n pọ si.

Ofin ti awọn olutẹdo akọkọ fi lelẹ, wipe awọn ọmọ ijọ nikan ni wọn le dibo tabi di ipo oṣelu mu yọri si iṣẹlẹ ti o buru jai. Wọn ṣe ofin yii lati le jẹ ki ilu o wa ni mimọ, ṣugbọn o fa iwa ibajẹ ninu ijọ. Niwọn igba ti o jẹ wipe jijẹ ọmọ ijọ ni a nilo lati le dibo tabi di ipo ilu mu, ọpọlọpọ ti o jẹ wipe ifẹ aye nikan ṣoṣo ni o wa lọkan wọn, ni wọn darapọ mọ ijọ laisi iyipada ọkan. Bayi ni awọn ti ko ni iyipada ọkan ṣe di pupọ ninu ijọ; ani ninu iṣẹ alufa, ki i ṣe awọn ti igbagbọ wọn ko tọna nikan ni wọn wa nibẹ, ṣugbọn awọn ti wọn ko mọ nipa agbara Ẹmi Mimọ ti n yini pada. Lẹẹkansi, a tun ri ayọrisi buburu ti a saba maa n ri ninu itan ijọ lati akoko Constantine titi di akoko yii, nipa gbigbe ijọ ró nipasẹ iranlọwọ ilu, nipa lilo agbara aye lati ṣe iranlọwọ fun iyinrere Ẹni ti o sọ wipe: "Ijọba Mi ki i ṣe ti aye yii." Johanu 18:36. Idapọ ijọ pẹlu ijọba, bi o ti wu ki o kere mọ, nigba ti o ba n fihan wipe o n jẹ ki aye sunmọ ijọ, ni tootọ, o n jẹ ki ijọ sunmọ aye ni.

Awọn ọmọ wọn gbagbe ẹkọ nla ti Robinson ati Roger Williams fi kọni, wipe otitọ n tẹsiwaju, wipe awọn Kristẹni nilati ṣetan lati gba gbogbo otitọ ti o ba tan si wọn lati inu ọrọ mimọ Ọlọrun. Awọn ijọ Protestant ni Amẹrika,—ati awọn ti wọn wa ni Europe pẹlu,—ti a fi oju rere han fun ni ọpọ yanturu nipa gbigba ibukun iṣẹ Atunṣe, baku lati tẹsiwaju ni oju ọna atunṣe. Bi o tilẹ jẹ wipe awọn olootọ perete dide, lati igba de igba, lati kede otitọ tuntun ati lati ṣe afihan awọn aṣiṣe ti a ti gba fun igba pipẹ, ọpọlọpọ, bii ti awọn Ju ni akoko Kristi tabi awọn atẹle popu ni akoko Luther, ni itẹlọrun lati gbagbọ bi awọn baba wọn ti gbagbọ, ati lati gbe gẹgẹ bi wọn ti gbe. Nitori naa, ẹsin

tun bajẹ di aṣa lasan; ti aṣiṣe ati igbagbọ ninu ohun asan, eyi ti wọn i ba sọ danu bi o ba jẹ wipe ijọ tẹsiwaju lati rin ninu imọlẹ ọrọ Ọlọrun di eyi ti wọn gbagbọ ti wọn tun nifẹsi. Bayii ni ẹmi ti iṣẹ Atunṣe ru soke ṣe rọra ku tan titi ti ijọ Protestant fi nilo atunṣe gẹgẹ bi ijọ Romu ti nilo rẹ ni akoko Luther. Iru ifẹ aye ati orun ẹmi, iru ibọwọ fun ero eniyan, ati fifi imọ eniyan rọpo ikọni Ọlọrun kan naa ni o wa.

Bi a ti pin Bibeli kaakiri ni ibẹrẹ ọrundun kọkandinlogun, ati imọlẹ nla ti o tan sinu aye nitori rẹ ko mu itẹsiwaju wa ninu imọ otitọ Ọlọrun, tabi titẹle ohun ti eniyan gbagbọ. Satani kò lè pa ọrọ Ọlọrun mọ wipe ki o ma de ọdọ awọn eniyan gẹgẹ bii ti igba atijọ; o ti wa ni arọwọtọ gbogbo eniyan; ṣugbọn lati le gbe ero inu rẹ jade, ko jẹ ki ọpọ awọn eniyan o kaa si. Awọn eniyan kọ lati wa inu Iwe Mimọ, nipasẹ eyi, wọn tẹsiwaju lati gba itumọ eke, ati lati fẹran awọn ikọni ti ko ni ipilẹ ninu Bibeli.

Nigba ti o ri ibaku akitiyan rẹ lati pa otitọ run nipasẹ inunibini, Satani tun pada si ilana ibarẹ aye ti o fa iyapa nla, ti o si fa dida ijọ Romu silẹ. O mi si awọn Kristẹni lati so ara wọn pọ, ki i ṣe pẹlu awọn abọrisa nisinsinyii, ṣugbọn pẹlu awọn ti wọn fi ara wọn han bi abọrisa, nipasẹ ifẹ ti wọn ni si ohun aye yii, ti wọn dabi ẹni ti n tẹriba fun ère. Abayọri ibaṣepọ yii buru jọjọ gẹgẹ bi ti igba akọkọ; igberaga ati inakuna n tẹsiwaju o n fi ẹsin boju, awọn ijọ si n dibajẹ. Satani tẹsiwaju lati yi awọn ikọni Bibeli pada, awọn aṣa eniyan ti n pa ọpọlọpọ eniyan run si n fi ẹsẹ mulẹ. Ijọ di awọn ikọni eniyan mu, o tun n gbeja wọn, dipo ki o jà fun "igbagbọ ti a fifun awọn eniyan mimọ lẹẹkan ṣoṣo." Bayii ni a ṣe ba ipilẹ ẹkọ ti awọn Alatunṣe ṣiṣẹ takuntakun fun ti wọn si jiya nitori rẹ jẹ.

17

Awọn Akéde Òwúrọ

Ọkan ninu awọn otitọ ti o ṣe pataki julọ ti o si ni ogo julọ ti a fihan ninu Bibeli ni ti ipadabọ Kristi lẹẹkeji lati pari iṣẹ nla ti irapada. Awọn eniyan Ọlọrun ti wọn jẹ arinrin-ajo, ti a fi silẹ fun igba pipẹ lati rin ni “agbegbe ati ojiji iku,” ni a fun ni ireti ti o ṣe iyebiye, ti o n mu ayọ wa, ninu ileri ifarahan Rẹ, Ẹni ti i ṣe “ajinde ati iye,” lati “mu awọn eniyan Rẹ ti a le kuro ni ilu wa sile.” Ikọni ti ipadabọ lẹẹkeji jẹ eyi ti o fi ara han kedere ninu Iwe Mimọ. Lati ọjọ tí tọkọtaya akọkọ ti yi ẹṣẹ ibanujẹ wọn kuro ni Edẹni, awọn ọmọ igbagbọ ti n duro de wiwa Ẹni ti a ṣeleri lati ba agbara apanirun jẹ ati lati da wọn pada si Paradise ti wọn ti padanu. Awọn eniyan mimọ ti igba atijọ wo ọjọ iwaju fun wiwa Mesaya ninu ogo, gẹgẹ bi imuṣẹ ireti wọn. A gba Enọku, iran keje lati ọdọ awọn ti wọn gbe ni Edẹni, ẹni ti o fi ọgọrun ọdun mẹta rin pẹlu Ọlọrun rẹ ninu aye, laaye lati ri wiwa Olugbala ni jijina réré. O si wipe, “Kiyesi, Oluwa n bọwa pẹlu ẹgbẹẹgbẹrun awọn ẹni mimọ Rẹ, lati wa ṣe idajọ gbogbo eniyan.” Juda 14, 15. Jobu, baba nla, ninu aṣalẹ ijiya rẹ sọ pẹlu igbẹkẹle ti ko mì wipe: “Mo mọ wipe Oludande mi wa laaye, yoo si dide nikẹyin lori ilẹ aye: . . . ninu ẹran ara mi, emi yoo ri Ọlọrun: Ẹni ti emi yoo ri funra mi, oju mi yoo ri i, ki si i ṣe ti ẹlomiran.” Jobu 19:25—27.

Wiwa Kristi lati mu akoko iṣakoso ododo wa ti mí si ọrọ otitọ pataki awọn onkọwe mimọ. Awọn akewi ati awọn woli inu Bibeli ti ṣe aṣaro lori rẹ pẹlu ina ọrun. Akọrin kọ nipa agbara ati ọlanla Ọba Israeli: “Lati Sioni wa, pipe ẹwa, Ọlọrun tan imọlẹ jade. Ọlọrun wa yoo wa, ki yoo si dakẹ. . . . Yoo ké sí awọn ọrun lati oke wa, ati si aye, ki o baa le ṣe idajọ awọn eniyan Rẹ.” O. Dafidi 50:2—4. “Jẹ ki awọn

ọrun o yọ, ki inu aye o si dun . . . niwaju Oluwa nitori ti O n bọ lati ṣe idajọ aye: yoo ṣe idajọ aye pẹlu ododo, ati awọn eniyan pẹlu otitọ Rẹ.” O. Dafidi 96:11—13.

Woli Aisaya wipe: “Ẹ dide, ki ẹ si kọrin, ẹyin ti n gbe ninu erupẹ: nitori ìrì rẹ dabi ìrì eweko, ilẹ yoo si sọ awọn oku jade.” “Awọn oku inu rẹ yoo wa laaye, wọn yoo dide pẹlu ara kiku mi.” “Yoo gbe iku mi ni iṣẹgun; Oluwa Ọlọrun yoo si nu omije kuro ni oju gbogbo eniyan; yoo si ko ẹgan awọn eniyan Rẹ kuro ni gbogbo aye: nitori Oluwa ni o sọ ọ. A yoo si sọ ni ọjọ naa wipe, Kiyesi, Ọlọrun wa ni eyi: awa ti duro de e, yoo si gba wa: Oluwa ni eyi; awa ti duro de e, inu wa yoo dun, a o si yọ ninu igbala Rẹ.” Aisaya 26:19; 25:8, 9.

Habakuku lọ ninu iran mimọ, o kiyesi ifarahan Rẹ. “Ọlọrun ti Teman jade wa, Ẹni Mimọ lati ori oke Parani. Ogo Rẹ bo awọn ọrun, aye si kun fun iyin Rẹ. Itansan Rẹ si dabi imọlẹ.” “O duro, O si wọn ile aye: O kiyesi, O si pin awọn orilẹ ede niya; a fọn awọn oke ayeraye ka, awọn oke igba laelae tẹriba: awọn ọna Rẹ wà titi ayeraye.” “Iwọ gun awọn ẹsin Rẹ ati kẹkẹ ẹsin igbala Rẹ.” “Awọn oke ri Ọ, wọn si wa rìrì: . . . ibú fọ ohùn rẹ, o si gbe ọwọ rẹ soke giga. Oorun ati oṣupa duro sojukan ni ibugbe wọn: wọn kọja nibi ọfa imọlẹ Rẹ, ati nibi itansan ogo didan Rẹ.” “Iwọ kọja lọ fun igbala awọn eniyan Rẹ, ani fun igbala pẹlu ẹni ami ororo Rẹ.” Habakuku 3:3, 4, 6, 8, 10, 11, 13.

Nigba ti Olugbala fẹ kuro ni ọdọ awọn ọmọ ẹyin Rẹ, O tù wọn ninu pẹlu idaniloju wipe Oun yoo pada wa: “Ẹ maṣe jẹ ki ọkan yin daru. . . . Ninu ile Baba Mi, ọpọ ibugbe ni o wa. . . . Emi n lọ pese aye silẹ fun yin. Bi Emi ba si lọ lati pese aye silẹ fun yin, Emi yoo pada wa lati gba yin si ọdọ Emi tikara Mi.” Johanu 14:1—3. “Ọmọ eniyan yoo wa ninu ogo Rẹ, ati gbogbo awọn angẹli mimọ Rẹ pẹlu Rẹ.” “Nigba naa ni yoo joko ni ori itẹ ogo Rẹ: gbogbo orilẹ ede yoo si pejọ siwaju Rẹ.” Matiu 25:31, 32.

Awọn angẹli ti wọn duro lẹyin ni ori oke Olifi lẹyin igbasoke Kristi tun ileri ipadabọ Rẹ sọ fun awọn ọmọ ẹyin: “Jesu yii kan naa, ti a gba kuro lọwọ yin lọ si ọrun, yoo pada wa ni ọna kan naa bi ẹyin ti ri ti O n goke lo si ọrun.” Iṣe 1:11. Aposteli Pọlu pẹlu jẹri nipasẹ Ẹmi Mimọ wipe: “Oluwa funra Rẹ yoo sọkalẹ lati ọrun wa pẹlu ariwo, pẹlu ohùn Olu angẹli, ati kàkàkí Ọlọrun.” I Tẹsalonika 4:16. Woli oke Patmosi sọ wipe: “Kiyesi, O n bọ pẹlu awọsanma; gbogbo oju ni yoo si ri I.” Ifihan 1:7

Awọn ogo “imubọsipo gbogbo nnkan, ti Ọlọrun sọ lati ẹnu gbogbo awọn woli mimọ Rẹ lati igba ti aye ti bẹrẹ,” (Iṣe 3:21) ro mọ iṣẹlẹ wiwa Rẹ. Nigba naa ni iṣakoso iwa buburu, eyi ti o ti wa fun ọjọ pipẹ yoo dopin; “ijọba aye yii” yoo di “ijọba Oluwa wa, ati ti Kristi Rẹ;

yoo si jọba titi laelae.” Ifihan 11:15. “Ogo Oluwa yoo farahan, gbogbo ẹran ara yoo si jumọ ri i.” “Oluwa Ọlọrun wa yoo jẹ ki òdodo ati iyin o yọ jade niwaju gbogbo awọn orilẹ ede.” Yoo si jẹ “ade ogo, ati ade ẹwa si iyoku awọn eniyan Rẹ.” Aisaya 40:5; 61:11; 28:5.

Nigba naa ni a o fi idi ijọba alaafia ti Mesaya ti a ti n reti fun igba pipẹ mulẹ labẹ gbogbo ọrun. “Oluwa yoo tu Sioni ninu: yoo tu gbogbo ibi isọdahoro rẹ ninu; yoo jẹ ki gbogbo awọn aginju rẹ o dabi Edẹni, ati awọn aṣalẹ rẹ bi ọgba Oluwa.” “A yoo fi ogo Lebanoni fun un, titayọ ogo Kamẹli ati Sharoni.” “A ki yoo pe ọ ni ẹni ti a kọ silẹ mọ; bẹẹ ni a ki yoo pe ilẹ rẹ ni Ahoro: ṣugbọn a yoo pe ọ ni Idunnu mi ati ilẹ rẹ ni Beulah.” “Bi ọkọ iyawo ti n yọ lori iyawo rẹ, bẹẹ ni Ọlọrun rẹ yoo yọ lori rẹ.” Aisaya 51:3; 35:2; 62:4, 5.

Wiwa Oluwa ni ireti gbogbo awọn atẹle Rẹ tootọ ni igba gbogbo. Ileri ti Olugbala fi silẹ ni ori oke Olifi wipe Oun n pada bọ mu ki ọjọ iwaju o fuyẹ fun awọn ọmọ ẹyin Rẹ, o fi ayọ ati ireti ti ibanujẹ ko le pa ku, ti wahala ko le sẹrọ kun inu ọkan wọn. Ninu ijiya ati inunibini, “ifarahan Ọlọrun wa nla ati Jesu Kristi Olugbala wa” ni “ireti ti o ni ibukun.” Nigba ti awọn Kristẹni ni Tesalonika kun fun ibaniję bi wọn ti n sin awọn ololufẹ wọn, ti wọn ni ireti lati wa laaye lati ri wiwa Oluwa, Pọlu, olukọ wọn, tọka wọn si ajinde ti yoo ṣẹlẹ ni igba wiwa Oluwa. Nigba naa ni awọn oku ninu Kristi yoo jinde, a o si gba wọn soke pẹlu awọn ti wọn wa laaye lati lọ pade Oluwa ninu afẹfẹ. O wa sọ wipe, “Bayi ni a yoo wa titi lae pẹlu Oluwa. Nitori naa, ẹ fi awọn ọrọ wọnyi tu ara yin ninu.” 1 Tẹsalonika 4:16—18.

Lori apata Patmosi, ọmọ ẹyin ti a fẹran gbọ ileri, “Nitootọ Emi n bọ kankan,” esi olùwọna ti o fọ sọ adura ijọ ninu gbogbo irin ajo rẹ, “Ani maa bọ wa Jesu Oluwa.” Ifihan 22:20.

Lati inu tubu, ibi idanasunni, ibi ibẹnilori, nibi ti awọn eniyan mimọ ati awọn ajẹriku ti jẹri si otitọ, ọrọ igbagbọ ati ireti wọn n jade wa fun ọpọ ọdun. Ọkan ninu awọn Kristẹni wọnyi sọ wipe, nitori ti wọn ni “idaniloju ajinde Rẹ, ati nitori naa, titi wọn ní igba wiwa Rẹ, nitori idi eyi, wọn fi oju tẹnbẹlu iku, wọn ri wipe wọn ga ju u lọ.” Wọn gba lati lọ si inu iboji ki wọn ba le “dide ni ominira.” Wọn wọna fun “Oluwa lati wá lati ọrun ninu ikuuku awọsanma pẹlu ogo Baba Rẹ, “ki O mu akoko ijọba naa wa fun awọn olododo”. Awọn Waldenses ni iru igbagbọ kan naa. Wycliffe wo ọjọ iwaju fun ifarahan Olurapada gẹgẹ bi ireti ijọ.

Luther sọ wipe: “O damiloju nitootọ, wipe ọjọ idajọ ko le jinna to ọgọrun ọdun mẹta mọ. Ọlọrun ko le jẹ, ko si ni jẹ ki aye buburu yii o tẹsiwaju fun igba pipẹ mọ.” “Ọjọ nla n sunmọle ninu eyi ti a o bi ijọba irira yii ṣubu.”

Melancthon sọ wipe, “Aye ti o dogbo yii ko jinna si opin rẹ.” Calvin rọ awọn Kristẹni “lati maṣe lọra, ki wọn fi tọkantọkan ni ifẹ si ọjọ wiwa Kristi gẹgẹ bi iṣelẹ ti o dara julọ;” o tun sọ wipe “gbogbo idile awọn olootọ yoo wọna fun ọjọ naa.” O sọ pe, “A nilati pongbẹ fun Kristi, a nilati wa A, ki a ṣe asaro, titi ti ọjọ nla naa a fi yọ, nigba ti Oluwa wa yoo fi ogo ijọba Rẹ han ni kikun.”

Knox Alatunṣe ti ilẹ Scotland sọ wipe, “Njẹ Jesu Oluwa ko ha gbe ẹran ara wa lọ si ọrun bi? ṣe ko wa ni pada wa bi? A mọ wipe yoo pada wa, yoo si ṣe e ni kankan.” Ridley ati Latimer, ti wọn fi ẹmi wọn lelẹ nitori otitọ, fi igbagbọ wọna fun wiwa Oluwa. Ridley kọwe wipe: “Aye, laisi iyemeji,—eyi ni mo gbagbọ, nitori naa ni mo fi sọ ọ—n lọ si opin. Pẹlu Johanu iranṣẹ Ọlọrun, ẹ jẹ ki a kigbe si Kristi Olugbala wa ninu ọkan wa, Maa bọ, Jesu Oluwa, wa.”

Baxter sọ wipe, “Ero nipa wiwa Oluwa ni o dun mọ mi, ti o si fun mi layọ julọ.” “Iṣẹ igbagbọ ati iṣesi awọn eniyan mimọ Rẹ ni lati fẹran wiwa Rẹ ati lati wọna fun ireti ti o ni ibukun.” “Bi iku ba jẹ ọta ikẹyin ti a o parun ni asiko ajinde, a le kọ nipa bi o ti yẹ ki awọn onigbagbọ o ṣe fi tọkantọkan wọna fun, ki wọn si gbadura fun ipadabọ Kristi lẹẹkeji, nigba ti a yoo ṣe iṣẹgun kikun ti o kẹyin yii.” “Eyi ni ọjọ ti o yẹ ki gbogbo onigbagbọ o wọna, ki wọn ni ireti, ki wọn si duro de, gẹgẹ bi aṣekagba gbogbo iṣẹ irapada wọn, ati gbogbo ifẹ ati akitiyan ọkan wọn.” “Oluwa, jẹ ki ọjọ alabukun yii o yara kankan!” Iru ireti ijọ apostoli niyi, ti “ijọ ninu aginju,” ati ti awọn Alatunṣe.

Ki i ṣe wipe asọtẹlẹ sọ nipa bi Kristi yoo ti wa, ati ohun ti O n bọ wa ṣe nikan, ṣugbọn o ṣe afihan awọn ohun ti eniyan a fi mọ igba ti o ba sunmọle. Jesu sọ wipe: “Ami yoo wa ninu oorun, ati oṣupa, ati irawọ.” Luku 21:25. “Oorun yoo ṣokunkun, oṣupa ki yoo si fi imọlẹ rẹ han, awọn irawọ oju ọrun yoo jabọ, a o si mi awọn agbara ti n bẹ ni oju ọrun. Nigba naa ni wọn o ri Ọmọ eniyan ti n bọ ninu ikuuku awọsanma pẹlu agbara nla ati ogo.” Maku 13:24—26. Onifihan ṣe alaye akọkọ ninu awọn ami ti yoo ṣẹlẹ ṣaaju ipadabọ lẹẹkeji bayi pe: “Ilẹ ríri nla si wà; oorun si dudu bi aṣọ ọfọ, oṣupa si dabi ẹjẹ.” Ifihan 6:12.

A ri awọn ami wọnyi ki ọrundun kọkandinlogun o to bẹrẹ. Ni imuṣẹ si isọtẹlẹ yii, ni ọdun 1755, ilẹ riri ti o buru julọ ti a ti i riri ṣẹlẹ. Bi o tilẹ jẹ wipe a saba maa n pe e ni ilẹ ríri ti Lisbon, o de ọpọ ilẹ Europe, Africa, ati America. A ni imọlara rẹ ni Greenland, iha iwọ oorun Indies, ni erekusu Madeira, ni Norway ati Sweden, Great Britain ati Ireland. O dé bi i iwọn milliọnu mẹrin maili. Imọlara rẹ pọ ni Africa bii ti Europe. Pupọ lara ilu Algiers ni o parun; ibi kan ti ko jinna pupọ si Morroco, abule kan ti o ni to bi ẹgbẹrun mẹjọ si mẹwa

eniyan ni o tẹri. Igbi omi nla rọlu bebe Spain ati Africa, o bo awọn ilu nla mọlẹ, o si fa ọpọlọpọ iparun.

Ni Spain ati Portugal ni a ti ni imọlara agbara rẹ julọ. Ni Cadiz, a sọ pe igbi omi ti o rọ wọle ga to ẹsẹ bata ọgọta. Awọn oke, "diẹ lara awọn ti wọn tobi julọ ni Portugal, mi kikankikan, lati ipilẹ wọn wa, diẹ lara wọn sán loke, wọn ya bolẹ ni ọna ti o lagbara, wọn si ṣubu si afonifoji ti o wa ni ẹba wọn. A gbọ wipe ina ṣẹyọ lati ara awọn oke wọnyi."

Ni Lisbon "a gbọ iró àrá ni isalẹ ilẹ, lọgan lẹyin eyi, ilẹ ti o mi tìtì bi eyi ti o pọ julọ ninu ilu naa ṣubu. Laarin iṣẹju mẹfa awọn bi ẹgbẹrun lọna ọgọta eniyan ni wọn ṣègbé. Òkun kọkọ sa sẹyin diẹ, ti isalẹ rẹ si gbẹ; o wa pada wa, o fi aadọta ẹsẹ tabi ju bẹẹ lọ ga ju bi o ti yẹ lọ." "Lara awọn iṣẹlẹ agbayanu ti wọn sọ wipe o ṣẹlẹ ni akoko ijamba ti Lisbon ni bi ibùdokọ oju omi kan ti o tẹri; okuta mabu ni a fi kọ gbogbo rẹ, pẹlu owo gọbọi. Ọpọ ero ni wọn salọ sibẹ fun aabo, gẹgẹ bi ibi ti ọwọ iparun ko ti le to wọn; ṣugbọn lojiji, ebute naa rì wọlẹ, pẹlu gbogbo awọn ti wọn wa ni ori rẹ, ko si si oku ẹnikankan ti o lefo si ori omi."

"Ìgbọn tìtì" ilẹ ríri yii "jẹ ki awọn ile ijọsin ati ile awọn ajẹjẹ ẹsin o ṣubu loju ẹsẹ, gbogbo ile nla inu ilu naa ati eyi ti o ju ida kan lọ ninu awọn ile ti a n gbe ni wọn wo lulẹ. Ni aarin wakati meji lẹyin igbọn titi yii, ina ṣẹyọ ni orişirişi ibi, ti o si jo kikankikan fun bi ọjọ mẹta, titi ti ilu naa fi parun tan. Ọjọ mimọ ni iṣẹlẹ ilẹ riri yii ṣẹlẹ nigba ti awọn ile ijọsin ati ile awọn ajẹjẹ ẹsin kun fun awọn eniyan, iwọnba awọn eniyan perete ni wọn sa asala." Ibẹru awọn eniyan kọja ohun ti a le ṣalaye. Ko si ẹni ti o sọkun; o kọja ẹkun. Wọn sa sihin sọhun, wọn n ṣe ránrán nitori ipaya ati iyalẹnu, wọn n lu oju ati aya wọn, pẹlu igbe, 'Misericordia! the world is at an end!' (Oṣe o! Aye ti parẹ!) Awọn iya gbagbe awọn ọmọ wọn, wọn n sare kiri pẹlu ère kekere Jesu lori agbelebu lọrun wọn. O ṣenilaanu, ọpọlọpọ ni wọn salọ sinu ile ijọsin fun aabo; ṣugbọn lasan ni a fi aami majẹmu han; lasan ni awọn ẹni ikaanu naa diro mọ pẹpẹ; awọn ère, awọn alufa, ati awọn eniyan tẹri sinu iparun kan naa." A ṣe işiro rẹ pe o to bi ẹgbẹrun lọna aadọrun eniyan ti wọn padanu ẹmi wọn lọjọ buruku naa.

Ni ọdun marundinlọgbọn lẹyin eyi, àmi miran ti a sọ nipa rẹ ninu asọtẹlẹ naa—iṣokunkun oorun ati oṣupa—fi ara han. Ohun ti o tun jẹ ki eyi o yanilẹnu si ni wipe a tọka si igba ti yoo ṣẹlẹ ni pato. Ninu ijiroro Olugbala pẹlu awọn ọmọlẹyin Rẹ ni ori oke Olifi, lẹyin ti o ṣe alaye akoko gbọọrọ ti ijiya ijọ,—1260 ọdun ti inunibini ijọ padi, nipa inira ti O ṣe ileri wipe a o gé kuru,—O wa ṣe alaye awọn iṣẹlẹ kan ti yoo ṣaaju wiwa Rẹ, O si da igba ti akọkọ ninu awọn wọnyi yoo ṣẹlẹ:

“Ni awọn ọjọ naa, lẹyin ipọnju naa, oorun yoo ṣokunkun, oṣupa ki yoo si fi imọlẹ rẹ han.” Maku 13:24. 1260 ọjọ tabi ọdun pari ni 1798. Ọdun marundinlogbọn ṣaaju eyi, inunibini ti fẹrẹẹ pari patapata. Lẹyin inunibini yii, gẹgẹ bi ọrọ Kristi, oorun yoo ṣokunkun. Ni ọjọ kọkandinlogun oṣu karun, 1780, asọtẹlẹ yii wa si imuṣẹ.

“O fẹrẹ dabi ẹnipe iṣẹlẹ yii da yatọ, gẹgẹ bi eyi ti o yanilẹnu julọ ti a ko tun le ṣe alaye rẹ, . . . ọjọ dudu ti May 19, 1780,—okunkun ti a ko le ṣalaye ṣu bolẹ ni gbogbo New England.”

Ẹni ti iṣẹlẹ naa ṣe oju rẹ kòró, ti o n gbe ni Massachusetts ṣe alaye rẹ bayi: “Ni aarọ, oorun yọ kedere, ṣugbọn laipẹ ikuuku bò ó mọlẹ. Ikuuku naa bo oju ọrun, o dudu, o si banilẹru, lọgan bi o ti n yọ, mọnamọna kọ, àrá sán, òjò diẹ si rọ. Ni bii aago mẹsan, ikuuku naa n wọ kuro, oju ọrun si dabi àwọ idẹ, ti àwọ ilẹ, apata, igi, ilé, omi, ati eniyan yipada nitori imọlẹ ti o ṣajeji yii. Lẹyin iṣeju diẹ, ikuuku dudu biribiri bo gbogbo oju ọrun, o wa fi alafo tooro kan loju ọrun sile, oju ọrun ṣokunkun ayafi bii aago mẹsan alẹ ni igba ẹrun. . . .

“Ibẹru, aniyan ati ipaya, n bo ọkan awọn eniyan. Awọn obinrin duro si ẹnu ọna, wọn n wo ita ti o ṣokunkun; awọn ọkunrin pada wale lati ibi iṣẹ wọn lori oko; awọn gbẹnagbẹna fi irin iṣẹ wọn silẹ, awọn alagbẹdẹ fi ewiri wọn silẹ, awọn onišowo fi idi òwò wọn silẹ. A tu awọn ile ẹkọ ka, pẹlu iwariri, awọn akẹkọ sa pada sile. Awọn arinrinajo duro ni ilé oko ti o sunmọ julọ. ‘Kini o n bọwa?’ ni gbogbo ẹnu ati ọkan n beere. O dabi ẹnipe ẹfuufu lile fẹ la ilẹ naa kọja, tabi pe akoko opin ohun gbogbo ti de.

“A tan abẹla; ibi idana si n tan yoyoyo afi bi aṣalẹ ti oṣupa ko yọ. . . . Awọn adiyẹ pada si itẹ wọn wọn lọ sun, awọn malu pejọ pọ si ile onjẹ, wọn n ké, awọn ọpọlọ n ké, awọn ẹyẹ n kọrin alẹ, awọn adan si n fo kiri. Ṣugbọn eniyan mọ wipe aṣalẹ koi tii de....

“Dr Nathaniel Whittaker, alufa ijọ Tabernacle ni Salem, ṣe isin ni ile ijọsin, o si waasu, ninu iwaasu rẹ o sọ wipe okunkun naa ki i ṣe lasan. Awọn olujọsin pejọ pọ ni ọpọlọpọ ibomiran. Awọn ẹsẹ iwaasu jẹ eyi ti o fihan wipe okunkun naa wa ni ibamu pẹlu asọtẹlẹ Iwe Mimọ. . . . Okunkun naa dudu julọ ni lọgan lẹyin agogo mọkanla.” “Ni ọpọlọpọ oko, o pọ ni ọsan debi wipe awọn eniyan ko le fi aago sọ iye akoko ti o lu, tabi jẹun, tabi ṣe iṣẹ ile wọn lailo ina abẹla. . . .

“Bi okunkun naa ti gbilẹ to kọja afẹnusọ. A ṣe akiyesi rẹ de ibi jijina réré ni iha ila oorun de Falmouth. Si iha iwọ oorun, o de ibi ti o jinna julọ ni Connecticut, titi de Albany. Lọ si iha gusu, o de eti bebe okun; lọ si iha ariwa, o lọ jinna de ibi ti ilẹ Amẹrika jinna de.”

Lẹyin okunkun biribiri ọjọ naa, fun bi wakati kan tabi meji ni irọlẹ, oju ọrun mọlẹ diẹ, oorun si fi ara han, bi o tilẹ jẹ wipe ikuuku dudu

ṣi bo o mọlẹ. “Lẹyin ti oorun wọ, ikuuku tun bo oju ọrun, oju-ọjọ si tete ṣokunkun.” “Ki i ṣe wipe okunkun ti aṣalẹ jẹ lasan, tabi wipe ko banilẹru bii ti ọsan; bi o tilẹ jẹ wipe oṣupa fẹrẹ yọ tan, a ko le da ohunkohun mọ lalaisi iranlọwọ atupa, eyi ti o dabi ẹnipe o mọlẹ jade lati inu okunkun awọn ara Ijibiti, ti ko le jẹ ki imọlẹ o kọja nigba ti a ba n wo o lati ile ẹlomiran tabi lati ọna jinjin.” Ẹni ti iṣẹlẹ naa ṣe oju rẹ so wipe: “Nigba naa, mo n ronu wipe bi a ba fi okunkun biribiri bo gbogbo ohun ti n tan imọlẹ ninu aye, tabi bi a ba pa wọn run, okunkun naa ko le pọ ju eyi lọ.” Bi o tilẹ jẹ wipe oṣupa ti yọ ni kikun ni aago mẹsan alẹ ọjọ naa, “ko ni agbara kankan lati tu okunkun biribiri naa ka.” Lẹyin aago mejila oru, okunkun naa kuro, nigba ti oṣupa si kọkọ fi ara han daradara, o pọn bi ẹjẹ.

May 19, 1780, duro ninu itan gẹgẹ bi “Ọjọ Dudu.” Lati akoko Mose, ko si okunkun ti o ṣe bẹyẹn dudu, ti o gbilẹ, ti o si pẹ ti a ti i ri. Alaye iṣẹlẹ yii ti awọn ti iṣẹlẹ naa ṣe oju wọn ṣe jẹ atunsọ ọrọ Oluwa ti woli Joẹli, ni ẹgbẹrun meji abọ (2500) ọdun sọ ṣaaju ki wọn to ṣẹlẹ: “Oorun yoo ṣokunkun, oṣupa yoo si di ẹjẹ, ki ọjọ nla Oluwa ti o lẹru o to de,” Joẹli 2:31.

Kristi ti sọ fun awọn eniyan Rẹ lati wọna fun awọn ami wiwa Rẹ, ki wọn si bú si ayọ bi wọn ṣe n ri awọn ami ti n sọ wipe Ọba wọn n bọ wá. O sọ wipe, “Nigba ti awọn nnkan wọnyi ba n ṣẹlẹ, ẹ wòkè, ki ẹ si gbe ori yin soke, nitori idande yin sunmọle.” O tọka awọn atẹle Rẹ si igi ti n ruwe, o si sọ wipe: “Nigba ti wọn ba n ruwe, ẹ wo o ki ẹ si mọ ninu ara yin wipe igba ẹrun sunmọ etile. Bẹẹ gẹgẹ, nigba ti ẹyin ba ri ti nnkan wọnyi ba n ṣẹlẹ, ẹ mọ wipe ijọba ọrun n sunmọ etile.” Luku 21:28, 30, 31.

Ṣugbọn bi ẹmi igberaga ati aṣa lasan ti rọpo ẹmi irẹlẹ ati ifọkansin ninu ijọ, ifẹ fun Kristi ati igbagbọ ninu wiwa Rẹ di tutu. Wọn kun fun ifẹ aye ati wíwá ifẹkufẹ ara, oju awọn ti wọn n pe ara wọn ni eniyan Ọlọrun fọ si awọn ikilọ Kristi nipa ifarahan Rẹ. A kọ ikọni nipa ipadabọ lẹẹkeji silẹ; a si ṣi awọn ẹsẹ Bibeli ti wọn sọ nipa rẹ tumọ titi ti a ko fi ni oye nipa rẹ mọ, ti wọn si gbagbe rẹ. Eyi wọpọ julọ ninu awọn ijọ ilẹ Amẹrika. Ominira ati ifọkanbalẹ ti gbogbo eniyan n jẹgbadun, ifẹ gbigbona fun ọrọ ati faaji, ti o jẹ ki wọn ni ifọkansin gbigbona fun wiwa owó, itara lati ni agbara ati lati di gbajugbaja, eyi ti o dabi ẹnipe o wa ni arọwọto gbogbo eniyan, jẹ ki awọn eniyan o gbe ifẹ ati ireti wọn si ori awọn ohun aye yii, wọn si fi ọjọ ẹlẹru, ninu eyi ti ohun gbogbo ti a n ri wọnyi yoo kọja lọ, si ọjọ jijina réré.

Nigba ti Olugbala tọka awọn ọmọ ẹyin Rẹ si awọn ami wiwa Rẹ, O sọ nipa ipo ifaṣeyin ti yoo wà ni kete ṣaaju ipadabọ Rẹ lẹẹkeji. Gẹgẹ bii ti ọjọ Noa, awọn akitiyan ati irọkẹkẹ okoòwò aye ati wiwa

faaji—rira, tita, gbingbin, kikọle, gbigbeyawo, ati fifunni ni iyawo—pẹlu ainaani Ọlọrun ati igbe aye ti n bọ. Iyanju Kristi fun awọn ti n gbe ni akoko yii ni pe: “Ẹ kiyesi ara yin ki ọkan yin maṣe kun fun ajẹki ati imutipara, ati ìgbòkègbodò aye yii, ki ọjọ naa ma baa ba yin ni airotẹlẹ.” “Nitori naa, ẹ maa ṣọna ki ẹ si maa gbadura nigba gbogbo, ki a baa le ka yin yẹ lati jẹ ọkan ninu awọn ti yoo la awọn ohun ti n bọ wa ṣẹ ja, ki ẹ si le duro niwaju Ọmọ eniyan.” Luku 21:34, 36.

Ọrọ Olugbala ninu iwe Ifihan ṣe alaye ipo ti ijọ wa ni akoko yii: “Iwọ ni orukọ wipe iwọ wa laaye, ṣugbọn iwọ ti ku.” A tun ṣe ikilọ ẹlẹru yii fun awọn ti wọn kọ lati ji dide kuro ninu ipo aibikita, ṣugbọn ti wọn ro wipe wọn wa ninu aabo wipe: “Bi iwọ ko ba ṣọna, Emi yoo dé si ọ gẹgẹ bi ole, iwọ ki yoo si mọ akoko ti Emi yoo wa si ọdọ rẹ.” Ifihan 3:13.

Awọn eniyan nilati mọ iru inu ewu ti wọn wa; wipe wọn nilati ji lati mura silẹ fun awọn iṣẹlẹ ti wọn rọ mọ akoko opin aanu. Woli Ọlọrun kede wipe: “Ọjọ Oluwa lagbara, o si ni ẹru gidigidi; tani yoo le duro dee?” Tani yoo le duro nigba ti O ba yọ, Ẹni ti, “oju Rẹ mọ ju atiwo iwa buburu lọ,” ti ko si le wo aiṣedeede.”? Joẹli 2:11; Habakuku 1:13. Si awọn ti n kigbe wipe, “Ọlọrun mi, a mọ Ọ,” sibẹ ti wọn n tẹ majẹmu Rẹ loju, ti wọn si mura lati tẹle ọlọrun miran lẹyin, ti wọn n fi aiṣedeede pamọ sinu ọkan wọn, ti wọn si fẹran ọna aiṣododo—si awọn wọnyi, ọjọ Oluwa yoo jẹ “okunkun ti o dudu biribiri, ki si i ṣe imọlẹ, ki yoo si didan kan ninu rẹ.” Hosia 8:21; O. Dafidi 16:4; Amosi 5:20. “Yoo si ṣe ni akoko naa,” ni Oluwa wi, “ni Emi yoo tu Jerusalẹmu wò pẹlu fitila, Emi yoo si fi iya jẹ awọn ti wọn n gbarale gẹdẹgẹdẹ wọn: ti wọn n sọ ninu ọkan wọn wipe, Oluwa ko ni ṣe rere, bẹẹ ni ko ni ṣe ibi.” Sefanaya 1:12. “Emi yoo fi iya jẹ araye nitori iwa buburu wọn, ati awọn eniyan buburu nitori aiṣedeede wọn; Emi yoo fi opin si igberaga awọn agberaga, Emi yoo si rẹ igberaga awọn eniyan buburu silẹ.” Aisaya 13:11. “Fadaka wọn tabi wura wọn ki yoo le gba wọn;” “ohun ini wọn yoo di ikogun, ilẹ wọn yoo si di ahoro.” Sefanaya 1:18, 13.

Woli Jeremaya, nigba ti o n wo ọjọ iwaju fun akoko ẹlẹru yii, sọ wipe: “O dun mi de inu ọkan. . . . Emi ko le dakẹ, nitori ti iwọ ti gbọ, ọkan mi, ohùn kàkàkí, ati idagiri ogun. Iparun lori iparun ni a n kigbe.” Jeremaya 4:19, 20.

“Ọjọ naa jẹ ọjọ ibinu, ọjọ wahala ati ipaya, ọjọ ìfiṣòfò ati isọdahoro, ọjọ okunkun ati ibanujẹ, ọjọ ikuuku ati okunkun dudu, ọjọ kakaki ati idagiri.” Sefanaya 1:15, 16. “Kiyesi, ọjọ Oluwa n bọ wa, . . . lati sọ ilẹ naa di ahoro: yoo si pa awọn ẹlẹṣẹ run kuro ninu rẹ.” Aisaya 13:9.

Nipa ọjọ nla yii ọrọ Ọlọrun, ni ọna ti o lẹru ati ni ede ti o muni lọkan julọ, pe awọn eniyan Rẹ lati ji kuro ninu aarẹ ẹmi ti o n mu ọkan wọn, ki wọn si wa oju Rẹ pẹlu ironupiwada ati irẹra-ẹni-silẹ: "Ẹ fun kakaki ni Sioni, ki ẹ si fun ohùn ipè ni ori oke mimọ Mi: ẹ jẹ ki gbogbo awọn olugbe ilẹ naa o bẹru: nitori ti ọjọ Oluwa n bọwa, nitori ti o sunmọ etile." "Ẹ yan awẹ, ẹ pe ajọ mimọ: ẹ kó awọn eniyan jọ, ẹ ya ajọ eniyan si mimọ, ẹ pe awọn alàgbà jọ, ẹ ko awọn ọmọde jọ: . . . ẹ jẹ ki ọkọ iyawo o jade kuro ninu iyẹwu rẹ, ati iyawo kuro ninu yara rẹ. Ẹ jẹ ki awọn alufa, awọn ojiṣẹ Oluwa, o sọkun laarin ìloro ati pẹpẹ." "Ẹ yipada si ọdọ Mi pẹlu gbogbo ọkan yin, ati pẹlu awẹ, ati pẹlu ẹkun, ati pẹlu ọfọ: ki ẹ si fa ọkan yin ya, ki si i ṣe aṣọ yin, ki ẹ si yipada si Oluwa Ọlọrun yin: nitori ti O jẹ oloore ọfẹ ati alaanu, O n lọra lati binu, O si kun fun inurere lọpọlọpọ." Joẹli 2:1, 15—17, 12, 13.

A nilati ṣe iṣẹ atunṣe nla lati pese awọn eniyan silẹ lati le duro ni ọjọ Ọlọrun. Ọlọrun ri wipe ọpọ awọn ti wọn pe ara wọn ni eniyan Oun ko kọle fun igba ainipẹkun, ninu aanu Rẹ, O fẹ ran iṣẹ iranṣẹ ikilọ lati le ta wọn ji kuro ninu orun wọn, ati lati dari wọn lati le wa ni imura silẹ fun wiwa Oluwa.

A ri ikilọ yii ninu iwe Ifihan 14. Nibi ni a ti ri ipele iṣẹ iranṣẹ mẹta ti awọn ẹda lati ọrun wa n kede rẹ, ati pe lọgan lẹyin eyi, Ọmọ eniyan wá lati kore "ikore aye." Akọkọ ninu awọn ikilọ yii kede idajọ ti n bọ. Woli naa ri angẹli kan ti n fo "ni agbede meji ọrun ti oun ti iyinrere ainipẹkun lati waasu fun awọn ti n gbe ori ilẹ aye, ati orilẹ ede, ati ẹya, ati ede, ati eniyan, o n wi ni ohun rara wipe, Bẹru Ọlọrun ki ẹ si fi ogo fun Un; nitori ti wakati idajọ Rẹ de: ki ẹ si sin Ẹni ti o da ọrun ati aye, ati okun, ati awọn orisun omi." Ifihan 14:6, 7.

A sọ wipe iṣẹ iranṣẹ yii wa lara "iyinrere ainipẹkun." A kò fun awọn angẹli ni iṣẹ iwaasu iyinrere, ṣugbọn awọn eniyan ni a fifun. A gba awọn angẹli mimọ laaye lati dari rẹ, wọn si ni aṣẹ lori awọn ẹgbẹ nla fun igbala awọn eniyan; ṣugbọn iṣẹ ikede iyinrere ni pato wà fun awọn iranṣẹ Kristi lori ilẹ aye.

Awọn olootọ eniyan, ti wọn ṣe igbọran si imisi ẹmi Ọlọrun ati awọn ikọni inu ọrọ Rẹ ni yoo kede ikilọ yii fun araye. Awọn ni awọn ti wọn tẹti si "ọrọ asọtẹlẹ ti o yè kooro," "imọlẹ ti n tan ni ibi okunkun, titi ti ọjọ yoo fi yọ, ti irawọ owuro yoo fi yọ." 2 Peteru 1:19. Wọn wa imọ Ọlọrun ju ohun iṣura ti o pamọ lọ, wọn ri wipe o "dara ju okoowo fadaka lọ, ati èrè rẹ ju wura didan lọ." Owe 3:14. Oluwa fi awọn ohun nla ti ijọba han wọn. "Aṣiri Oluwa wa pẹlu awọn ti wọn bẹru Rẹ. Yoo si fi majẹmu Rẹ han fun wọn." O. Dafidi 25:14

Ki i ṣe awọn ọjọgbọn ninu ẹkọ Ọlọrun ni wọn ni oye otitọ yii, tabi ti wọn ṣiṣẹ lati kede rẹ. Bi o ba jẹ wipe awọn wọnyi jẹ alore olootọ, ti

wọn n fi pẹlẹkutu ati adura n kẹkọ Iwe Mimọ ni, wọn i ba mọ akoko òru; awọn asọtẹlẹ i ba fihan wọn awọn iṣẹlẹ to fẹ ṣẹlẹ. Ṣugbọn wọn ko duro ninu ipo yii, a si fi iṣẹ iranṣẹ naa fun awọn ti ko tó wọn. Jesu sọ wipe: “Ẹ rin nigba ti ẹyin ni imọlẹ, ki okunkun ma baa ba yin.” Johanu 12:35. Awọn ti wọn yiju kuro ninu imọlẹ ti Ọlọrun fifunni, tabi ti wọn kọ lati wa nigba ti o wà ni arọwọto wọn, wà ninu okunkun. Ṣugbọn Olugbala kede wipe: “Ẹnikẹni ti o ba tẹle Mi, ki yoo rin ninu okunkun, ṣugbọn yoo ni imọlẹ iye.” Johanu 8:12. Ẹnikẹni ti o ba fi tọkantọkan wa lati ṣe ifẹ Ọlọrun, ti o n fi tọkantọkan ṣe igbọran si imọlẹ ti a fifun, yoo gba imọlẹ nla si; a yoo ran irawọ ti n tan lati ọrun wa lati dari iru ọkan bẹẹ sinu gbogbo otitọ.

Ni igba ti Kristi wa ni akọkọ awọn alufa ati akọwe Ilu Mimọ, awọn ti a fi ọrọ Ọlọrun fun, i ba mọ awọn ami akoko ti wọn i ba si kede wiwa Ẹni ti a ti ṣeleri. Asọtẹlẹ Mika sọ nipa ibi ti a o bi I si; Danieli ṣe alaye igba wiwa Rẹ. Mika 5:2; Danieli 9:25. Ọlọrun gbe awọn asọtẹlẹ wọnyi le awọn adari Ju lọwọ; wọn wa ni airiwi bi wọn ko ba mọ, ki wọn si kede wipe wiwa Mesaya ti sunmọ etile. Aimọkan wọn jẹ abayori aika nnkan si, eyi ti i ṣe ẹṣẹ. Awọn Ju n kọ ohun iranti fun awọn woli Ọlọrun ti a pa, nigba ti wọn n fihan nipa itẹriba wọn fun awọn eniyan nla aye wipe wọn n jọsin awọn iranṣẹ Satani. Ija fun ipo ati agbara laarin awọn eniyan gba wọn lọkan, wọn fi oju fo ọla ọrun eyi ti Ọba ọrun fi n lọ wọn da.

Pẹlu ifẹ ọlọwọ, ti o jinlẹ, ni o yẹ ki awọn alagba Israeli fi kọ ẹkọ nipa ìbí, akoko, ati awọn ayika iṣẹlẹ ti o tobi julọ ninu itan aye—wiwa Ọmọ Ọlọrun lati pari iṣẹ irapada eniyan. O yẹ ki gbogbo awọn eniyan o ṣọna ki wọn si duro ki wọn baa le wà lara awọn ti yoo kọkọ ki Olurapada aye kaabọ. Ṣugbọn, kiyesi, ni Bẹtlẹhẹmu, awọn arinrinajo meji ti o rẹ lati awọn oke Nasareti rin gbogbo adugbo tooro lọ si iha ariwa opin ilu, wọn ko ri ibi isinmi ati ilé ìgbé fun aṣalẹ. A ko ṣi ilẹkun kankan silẹ lati gba wọn. Nikẹyin, wọn ri ibi aabo ninu agọ kan ti a pese silẹ fun malu, nibẹ si ni a bi Olugbala aye si.

Awọn angẹli ọrun ti ri ogo ti Ọmọ Ọlọrun ni pẹlu Baba ki aye o to wà, wọn si wọna pẹlu ifẹ gbigbona fun ifarahan Rẹ lori ilẹ aye gẹgẹ bi iṣẹlẹ ti o kun fun ayọ nla fun awọn eniyan. A ran awọn angẹli lati sọ iroyin ayọ naa fun awọn ti wọn ṣetan lati gba, ti wọn yoo si fi tayọtayọ sọ ọ fun awọn olugbe aye. Kristi ti rẹ ara Rẹ silẹ lati gbe ara eniyan wọ; yoo gbe ẹru wahala nla ti a ko le ṣalaye rù bi O ti n fi ọkan Rẹ ṣe etutu fun ẹṣẹ; sibẹ, ani ninu irẹsilẹ Rẹ, awọn angẹli n fẹ ki Ọmọ Ọga ogo O fi ara han niwaju eniyan pẹlu irisi ati ogo ti o wà ni ibamu pẹlu iwa Rẹ. Ṣe awọn eniyan nla aye yoo pejọ pọ si olu ilu Israeli lati ṣe ayẹsi wiwa Rẹ bi? Njẹ ọgọọrọ awọn angẹli ti wọn wa nibe yoo fihan awọn ẹgbẹ ti n wọna bi?

Angẹli kan bẹ aye wò lati wo awọn ti wọn mura silẹ lati ki Kristi kaabọ. Ṣugbọn ko ri ami wipe wọn reti Rẹ. Ko gbọ ohùn iyin ati iṣẹgun wipe akoko wiwa Mesaya ti sunmọ. Angẹli naa rababa fun igba diẹ lori ilu ti a yan ati tẹmpili nibi ti Ọlọrun ti fi ara Rẹ han fun ọpọ ọdun; ṣugbọn nibi, iru aibikita kan naa ni o wa. Awọn alufa, ninu iwuga ati igberaga wọn n ṣe irubọ ti o ti ni abawọn ninu tẹmpili. Awọn Farisi n ba awọn eniyan sọrọ pẹlu ohùn rara, tabi wọn n gbadura afunnu wọn ninu adugbo ilu. Ni aafin awọn ọba, ni apejọpọ awọn alarojinlẹ, ninu ile ẹkọ awọn rabbi, gbogbo wọn lapapọ ni ko kọbi ara si ohun iyanu ti o mu ayọ ati iyin kun gbogbo ọrun—wipe Olurapada eniyan ti fẹ fi ara han ninu aye.

Ko si ẹri kan wipe a n reti Kristi, ko si imurasilẹ kankan fun Ọmọ alade iye. Pẹlu iyalẹnu iranṣẹ lati ọrun fẹ pada si ọrun pẹlu iroyin atinilójú yii, nigba ti o ri ẹgbẹ awọn darandaran kan ti wọn n ṣọ agbo ẹran wọn ni alẹ, wọn n wo oju ọrun, wọn n ronu lori asọtẹlẹ nipa Mesaya ti yoo wa si aye, wọn n wọna fun dide Olurapada aye. Nibi ni a ti ri ẹgbẹ kan ti wọn ṣetan lati gba iṣẹ iranṣẹ lati ọrun. Lojiji angẹli Oluwa fi ara han, o n kede iroyin ayọ nla naa. Ogo ọrun mọlẹ si gbogbo ilẹ, ogunlọgọ awọn angẹli ti a ko le ka farahan, afi bi ẹnipe ayọ naa tobi ju fun iranṣẹ kan lati mu wa lati ọrun, ọpọ ìró ohùn bu yọ ninu orin ti gbogbo orilẹ ede ti a gbala yoo kọ lọjọ kan: “Ogo fun Ọlorun ni oke ọrun, ati lori ilẹ aye alaafia, inu rere si gbogbo eniyan.” Luku 2:14.

Ah iru ẹkọ wo ni itan agbayanu ti Bẹtlẹhẹmu yii jẹ! O ba aigbagbọ wa, igberaga wa ati iwa mototan wa wi. O ki wa nilọ lati ṣọra, ki a ma baa kuna lati mọ awọn ami akoko, ti ki yoo ni jẹ ki a mọ akoko ibẹwo wa, nitori aibikita wa.

Ki i ṣe ni ori awọn oke Judea nikan, ki i ṣe laarin awọn darandaran nikan ni awọn angẹli ti ri awọn ti n wọna fun wiwa Mesaya. Ni ilẹ awọn keferi pẹlu, a ri awọn ti wọn n wọna fun; wọn jẹ ọlọgbọn eniyan, wọn jẹ ọlọrọ, ijoye ni wọn, awọn alarojinlẹ lati iha ila oorun. Wọn ni oye nipa iṣẹda, awọn Amoye ri Ọlọrun ninu iṣẹ ọwọ Rẹ. Lati inu Iwe Mimọ Heberu wọn kọ nipa Irawọ kan ti yoo ti Jakobu jade wa, pẹlu ifẹ atọkanwa, wọn duro de wiwa Rẹ, Ẹni ti ki yoo jẹ “Itunu Israeli” nikan, ṣugbọn “Imọlẹ lati mọlẹ si awọn Keferi” ati “fun igbala titi de opin aye.” Luku 2:25, 32; Iṣe 13:47. Wọn n wa imọlẹ, imọlẹ lati itẹ Ọlọrun si tan si ọna ẹṣẹ wọn. Nigba ti awọn alufa ati rabbi ni Jerusalẹmu, awọn ti a yan lati pa otitọ mọ ati lati ṣe itumọ rẹ, wà ninu okunkun, irawọ ti a ran lati Ọrun dari awọn Keferi ajeji wọnyi lọ si ibi ti a bi Ọba tuntun si.

Fun “awọn ti n wọna fun” ni Kristi yoo “farahan fun ni igbakeji, laisi ẹṣẹ si igbala.” Heberu 9:28. Gẹgẹ bi iroyin ìbí Olugbala, ki i ṣe awọn

adari ẹsin ni a fi iṣẹ iranṣẹ ipadabọ lẹẹkeji fun. Wọn kuna lati daabo bo ibaṣepọ wọn pẹlu Ọlọrun, wọn si kọ imọlẹ lati ọrun silẹ; nitori naa, a ko ka wọn kun iye ti apostoli Pọlu ṣe alaye rẹ wipe: "Ṣugbọn ẹyin ara ko si ninu okunkun ki ọjọ naa ma baa ba yin bi ole. Ọmọ imọlẹ ni ẹyin i ṣe ati ọmọ ọsan: ẹ ki i ṣe ti oru tabi ti okunkun." I Tẹsalonika 5:4, 5.

Awọn alore lori odi Sioni ni o yẹ ki wọn kọkọ gba iroyin wiwa Olugbala, ẹni akọkọ lati gbe ohun wọn soke lati kede wipe ó wa nitosi, ẹni akọkọ lati ṣe ikilọ fun awọn eniyan lati mura silẹ fun wiwa Rẹ. Ṣugbọn wọn wa ni ifọkanbalẹ, wọn lá àlá alaafia ati aabo, nigba ti awọn eniyan n sun ninu ẹṣẹ wọn. Jesu ri ijọ Rẹ, bi igi ọpọtọ ti ko ni eso, ti o kun fun ewé agabagebe, sibẹ, ko ni eso ti o ṣe iyebiye. Wọn fọnnu wipe wọn tẹle aṣa ẹsin, ṣugbọn wọn ko ni—ẹmi irẹlẹ nitootọ, ironupiwada ati igbagbọ eyi kan ṣoṣo ti o le jẹ ki isin wọn o jẹ itẹwọgba ni ọdọ Ọlọrun. Dipo awọn ẹbun Ẹmi, wọn fi igberaga, aṣa, òǵo asán, imọ-ti-ara-ẹni-nikan ati ininilara han. Ijọ ti o n fa sẹyin di oju rẹ si awọn ami akoko. Ọlọrun ko kọ wọn silẹ, bẹẹ ni ko jẹ ki ododo Rẹ o baku; ṣugbọn wọn yà kuro ni ọdọ Rẹ, wọn si pin ara wọn niya kuro ni ọdọ ifẹ Rẹ. Nitori ti wọn kọ lati ṣe ohun ti o yẹ, awọn ileri ibukun Rẹ ko le ṣẹ si wọn lara.

Iru atubọtan bayi ni o maa n tẹle ainaani ati aiṣiṣẹ lori imọlẹ ati anfani ti Ọlọrun fifunni. Ayafi bi ijọ ba tẹsiwaju lati tẹle iṣeun Rẹ, ti wọn n gba gbogbo itansan imọlẹ, ti wọn n ṣe gbogbo ojuṣe ti a fihan, laiṣe bẹẹ, ẹsin yoo fasẹyin di ṣiṣe aṣa lasan, ti ẹmi iwabiọlọrun ti o ṣe pataki yoo si poora. Lati igba de igba ni otitọ yii ti n fi ara han ninu itan ijọ. Ọlọrun fẹ ki awọn eniyan Rẹ o fi iṣẹ igbagbọ han ati igbọran ti o wa ni ibamu pẹlu ibukun ati anfani ti a fifun wọn. Igbọran nilo irubọ ati agbelebu; idi si ni yii ti ọpọlọpọ ti wọn pe ara wọn ni atẹle Kristi fi kọ lati gba imọlẹ lati ọrun, ati bi i ti awọn Ju igbaani, wọn kò mọ igba ibẹwo wọn. Luku 19:44. Nitori igberaga ati aigbagbọ wọn, Oluwa ré wọn kọja, O si fi otitọ Rẹ han fun awọn, bi i ti awọn oluṣọ aguntan ti Bẹtlẹhẹmu ati awọn Amoye lati iha ila oorun wa, ti wọn ṣe igbọran si gbogbo imọlẹ ti wọn gba.

18

Alatunṣe Ti Ilẹ Amẹrika

Ọkunrin agbẹ olododo ati olootọ ti a ṣi lọna lati ṣeyemeji lori aṣẹ Ọlọrun ninu Iwe Mimọ, sibẹ ti o fẹ mọ otitọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ, ni ẹni ti Ọlọrun yan ni ọna pataki lati jẹ adari ninu kikede ipadabọ Jesu lẹẹkeji. Bii ti ọpọ awọn Alatunṣe iyoku, ni ibẹrẹ aye rẹ, William Miller jijadu pẹlu aini, o si ti ipasẹ eyi kọ ẹkọ nla nipa agbara ati iṣẹra ẹni. Awọn ara idile ti o ti jade wa ni iwa lati maṣe gbe ara le ẹnikẹni, wọn ni ẹmi ti o fẹran ominira, ẹmi iforiti ati ẹmi ifẹ ilẹ baba ẹni—awọn iṣesi ti wọn han kedere ninu iwa rẹ. Baba rẹ jẹ ọgagun ninu ẹgbẹgun Ominira, a si lè tọpasẹ ifi-ara-ẹni-rubọ rẹ ninu wahala ati ijiya àkókò lile naa ninu ibẹrẹ igbesi aye Miller ti o ni wahala.

Ara rẹ pe, ani ni igba èwe, o ṣe afihan agbara iṣọwọronu ti ki i ṣe lasan. Bi o ti n dagba ni eyi si n fi ara han si. Iye rẹ ji pepe, o si yè kooro, o n pongbẹ pupọ fun imọ. Bi o tilẹ jẹ wipe ko ni anfani lati lọ si ile ẹkọ, ifẹ rẹ fun ẹkọ ati iwa iṣọraronu ati wiwadi nnkan finifini sọ ọ di ẹni ti idajọ rẹ yè kooro, ti o si n ri nnkan kedere. O ni iwa ti a ko le gan ati orukọ ti a lè jowu fun, nitori pe a mọ ọ si olootọ, ẹni ti ki i na inakuna ati ẹni ti o lawọ. Nipasẹ agbara ati iṣẹ ṣiṣe, o tete ni oye bi o tilẹ jẹ wipe o si tẹsiwaju ninu ẹkọ kikọ rẹ. O ṣe gbogbo iṣẹ ilu ati ti ologun pẹlu oriyin ti o si dabi ẹnipe ọna ọrọ ati ọla ṣi silẹ fun.

Iya rẹ jẹ obinrin ti o ni ifọkansin ti o lagbara, ni igba ewe rẹ, o ti ni ironu lọna ẹsin. Ni igba ewe rẹ ẹwẹ, o ba ara rẹ ni awujọ awọn ti wọn gbagbọ wipe Ọlọrun ko naani aye yii mọ, ipa wọn lagbara jọjọ nitori pe pupọ ninu wọn ni o jẹ ọmọ ilu rere ti wọn si ni iwa ati inu rere. Wọn gbe ni awujọ awọn Kristẹni, nitori naa, awujọ wọn nipa lori iwuwasi wọn. Inu Bibeli ni wọn ti ri awọn iwa ti o mu ki a bọwọ

fun wọn ati eyi ti o jẹ ki a fi ọkan tan wọn; sibẹ wọn ṣi awọn ẹbun rere wọnyi lo debi pe wọn fi n tako Ọlọrun. Nipa ibaṣepọ pẹlu awọn eniyan wọnyi, Miller gba iṣọwọronu wọn. Ọna ti wọn n gba tumọ Iwe Mimọ ni akoko naa fun ni awọn iṣoro kan ti o dabi ẹnipe ko le bori; sibẹ igbagbọ rẹ tuntun yii, nigba ti o ti Bibeli si ẹgbẹ kan, ko fun ni ohun ti o dara ju u lọ lati rọpo rẹ, ko si ni ifọkanbalẹ. O tẹsiwaju lati gba awọn nnkan wọnyi gbọ fun bi ọdun mejila. Ṣugbọn nigba ti o wa ni ọmọ ọdun mẹrinlelogbọn, Ẹmi Mimọ fi ọwọ ba a lọkan lati mọ nipa ipo rẹ gẹgẹ bi ẹlẹṣẹ. O ri wipe ninu igbagbọ oun tẹlẹ yii, ko si idaniloju ayọ lẹyin isa oku. Ọjọ iwaju ṣokunkun, o kun fun ibanujẹ. Nigba ti o n sọ nipa ero rẹ ni akoko yii, o sọ wipe:

"Iparun ayeraye jẹ ero ti o tutu, ti o tun n ko otutu ba ni, tí idajọ si jẹ iparun ti o daju fun gbogbo eniyan. Awọn ọrun dabi idẹ lori mi, ti ilẹ si dabi irin labẹ ẹsẹ mi. Iye ainipekun—kini o tumọ si? Ati iku—kini o tumọ si? Bi mo ti n ronu si, bẹẹ naa ni awọn idahun mi n tuka. Mo ṣa ipa lati maṣe ronu mọ, ṣugbọn n ko le ṣe akoso lori ero mi. Mo jẹ ẹni oṣi, ṣugbọn mi o mọ ohun ti o fa a. Mo kùn, mo tun ṣe aroye, ṣugbọn mi o mọ ẹni ti mo n ṣe e si. Mo mọ wipe aṣiṣe wa, ṣugbọn mi o mọ bi mo ti le ri i, tabi bi mo ti le ri ohun ti o tọna. Mo kẹdun, ṣugbọn ko si ireti."

O tẹsiwaju ninu ipo yii fun oṣu diẹ. O sọ pe: "Lọgan mo ni imọlara iwa Olugbala ninu iye mi. O dabi ẹnipe ẹnikan le wa ti o dara ti o si laanu lati le ṣe imukuro ẹṣẹ wa funra rẹ, ki o si ti ipa rẹ gba wa la lati ma baa jiya ẹṣẹ. Lọgan ni mo ni imọlara bi iru ẹni bẹẹ a ti dara to, mo si ronu wipe mo le sọ ara mi si ọwọ rẹ, ki n si gbẹkẹle aanu iru ẹni bẹẹ. Ṣugbọn ibeere ti o jade ni wipe, Bawo ni a ṣe le mọ wipe iru ẹni bẹẹ wa? Yatọ si Bibeli, mo ri wipe mi o le ri ẹri wipe iru Olugbala bẹẹ wa, tabi nipa ọjọ iwaju...

"Mo ri wipe Bibeli ṣe akajuwe iru Olugbala ti mo nilo gan an; o wa yamilẹnu wipe bawo ni iwe ti a ko mí sí ṣe le ni awọn ikọni ti wọn ba aini aye ti o ṣubu yii pade rẹgi. O di dandan fun mi lati gbagbọ wipe Iwe Mimọ nilati jẹ ifihan lati ọdọ Ọlọrun. Wọn di idunnu mi; ninu Jesu mo ri ọrẹ. Olugbala di eyi ti o lọla julọ laarin ẹgbẹẹgbẹrun; Iwe Mimo ti o si ṣokunkun ti ko si ba ara mi mu tẹlẹ, wa di fitila si ẹsẹ mi ati imọlẹ si ipa ọna mi. Ọkan mi balẹ o si wa ni alaafia. Mo ri wipe Oluwa Ọlọrun jẹ Apata laarin okun aye. Bibeli wa di ohun ti mo n kọ julọ, lotitọ mo le sọ wipe, mo wá inu rẹ pẹlu ayo kikun. Mo ri wipe a koi tii sọ idaji rẹ fun mi. O yamilẹnu idi ti mi o fi ri ẹwa ati ogo rẹ tẹlẹ, o si jọmi loju wipe mo tilẹ le kọ ọ silẹ. Gbogbo ohun ti a fihan ni ọkan mi n fẹ, ti o si jẹ iwosan fun aisan ọkan mi. Mi o ni ifẹ lati ka iwe kankan mọ, mo si pese ọkan mi silẹ lati gba ọgbọn lati ọdọ Ọlọrun."

Miller jẹwọ igbagbọ rẹ ni gbangba ninu ẹsin ti o kọ silẹ. Ṣugbọn awọn ọrẹ rẹ ti wọn jẹ alaigbagbọ kò lọra lati sọ gbogbo koko ọrọ eyi ti oun funra rẹ saba maa n lo lati tako aṣẹ Ọlọrun ninu Iwe Mimọ. Ni akoko yii, ko wa ni imuratan lati da wọn lohun; ṣugbọn o ronu wipe bi Bibeli ba jẹ ifihan lati ọdọ Ọlọrun, o nilati ba ara rẹ mu; ati nitori pe a fifunni lati jẹ ilana fun eniyan, a nilati ṣe e ki o ba oye rẹ mu. O pinnu lati kọ ẹkọ Iwe Mimọ funra rẹ, ki o si ri idaniloju boya gbogbo awọn ohun ti o jọ wipe pe wọn tako ara wọn ko le ṣe e ṣalaye.

Pẹlu akitiyan lati ti ohun gbogbo ti o mọ tì si ẹgbẹ kan, o kọ awọn alaye lori Bibeli silẹ, o fi awọn ẹsẹ Iwe Mimọ we ara wọn nipa lilo ajuwe ati atọka. O tẹsiwaju ninu ẹkọ rẹ pẹlu eto; o bẹrẹ pẹlu Jẹnẹsisi, o n ka a lẹsẹẹsẹ. Ko yara ju bi ayọka naa ba ti ṣe yee lọ ni ọna ti ko fi ni ko itiju ba. Nigba ti o ba ri ohun ti o takókó, iṣe rẹ ni lati fi we awọn ẹsẹ miran ti o dabi ẹnipe wọn ni i ṣe pẹlu ohun ti o n ṣe ayẹwo rẹ lọwọ. Gbogbo ọrọ ni o gba laaye lati ni ipa ti o tọ lori koko ẹsẹ naa, bi ero rẹ lori rẹ ba ti jọra ni apapọ pẹlu gbogbo ayọka naa, kii tun ṣe wahala mọ. Bayi nigba ti o ba ri ẹsẹ kan ti o nira lati yé ni, a wa alaye rẹ ninu awọn abala miran ninu Iwe Mimọ. Bi o ti n kọ ẹkọ pẹlu adura tọkantọkan fun ilaloye lati ọdọ Ọlọrun, eyi ti o dabi ẹnipe o ṣokunkun si oye rẹ a mọlẹ kedere. O ni iriri awọn ọrọ Onisaamu "Iwọle ọrọ Rẹ n funni ni imọle; o n fi oye fun òpè." O. Dafidi 119:130.

O kẹkọ iwe Danieli ati Ifihan pẹlu ifẹ gbigbona, o n lo ọgbọn itumọ ti o lo ni abala ti o ku, o si ri pẹlu ayo nla wipe oye awọn ami isọtẹlẹ lè yé eniyan. O ri wipe awọn asọtẹlẹ, nibi ti a mu wọn ṣẹ de, ṣẹlẹ gẹgẹ bi o ti ri gan an; wipe gbogbo àmì, àkàwé, òwe, afiwe, abbl., ni a ṣe itumọ rẹ, boya ni aarin ibi ti a ti lo wọn, tabi ki a ti ṣe itumọ ohun ti wọn n sọrọ nipa ninu abala miran ninu Iwe Mimọ, ati pe nigba ti a ba ti ṣe alaye bẹẹ, a nilati ṣe itumọ rẹ bi o ti ri gan an. O sọ wipe, "Bayi ni o ṣe tẹmilọrun wipe Bibeli jẹ eto awọn otitọ ti a fihan, ti o han gbangba wipe a fifunni, bi o ba tilẹ jẹ wipe arinrinajo naa jẹ ope, ko nilo lati kọsẹ ninu rẹ." Ikọ kan lé èkejì ninu èwòn jé èrè akitiyan rẹ, bi o ti n tọpasẹ awọn akọsilẹ nla ti asọtẹlẹ. Awọn angẹli n dari iye rẹ, wọn si n fi Iwe Mimọ ye e.

Ni lilo ọna ti awọn asọtẹlẹ gbà wá si imuṣẹ ni atẹyinwa ṣe odiwọn lati ṣe ipinu awọn ti n bẹ ni ọjọ iwaju, o ri daju wipe ohun ti ọpọ eniyan gbagbọ nipa iṣejọba Kristi ni ti ẹmi—ijọba ẹgbẹrun ọdun ṣaaju opin aye—ko ni atilẹyin ọrọ Ọlọrun. Ikọni yii, ti o n tọka si ẹgbẹrun ọdun ti o kun fun ododo ati alaafia ṣaaju wiwa Oluwa funra Rẹ, sun ẹru ọjọ Ọlọrun siwaju. Ṣugbọn bi o tile wu ki o tẹnilọrun to, o tako ikọni Kristi ati ti awọn apostoli Rẹ, wọn kede wipe ki alikama ati epo maa jumọ dagba pọ titi fi di akoko ikore, opin aye; wipe "awọn ẹni buburu

ati ẹlẹtan a maa buru si;" wipe "ni awọn ọjọ ikẹyin, igba ewu yoo de;" ati wipe ijọba okunkun yoo tẹsiwaju titi fi di wiwa Oluwa ti yoo si pa a run pẹlu ẹmi ẹnu Rẹ, yoo si ṣe e lọṣẹ pẹlu itansan wiwa Rẹ." Matiu 13:30, 38—40; 2 Timoti 3:13, 1; 2 Tẹsalonika 2:8.

Ijọ Apostoli ko gba ikọni ti iyipada araye ati ti iṣakoso Kristi ni ti ẹmi. Kii ṣe gbogbo Kristẹni ni wọn gba a (ikoni yii) titi fi di ibẹrẹ ọrundun kejidinlogun. Gẹgẹ bi awọn ẹkọ eke iyoku, ohun buburu ni o yọri si. O kọ awọn eniyan lati wò jinna réré si ọjọ iwaju fun ọjọ wiwa Oluwa, o si ṣe idena fun wọn lati fi iye si awọn ami ti wọn kede wipe O ti sunmọle. O fa igboya ati aabo ti ko fẹsẹ mulẹ, o si jẹ ki ọpọlọpọ eniyan o maṣe naani imurasilẹ ti o yẹ lati ṣe lati le pade Oluwa wọn.

Miller ri wipe wiwa Kristi gẹgẹ bi eniyan, ati ni ojukoju jẹ ohun ti a kọni kedere ninu Iwe Mimọ. Pọlu sọ wipe: "Oluwa funra Rẹ yoo sọkalẹ lati ọrun pẹlu ariwo, pẹlu ohùn Olu awọn angẹli, ati kakaki Ọlọrun." I Tẹsalonika 4:16. Bakan naa ni Olugbala sọ wipe: "Wọn yoo ri Ọmọ eniyan ti O n bọ wa lati inu ikuuku awọsanma pẹlu agbara ati ogo nla." Matiu 24: 30, 27. Gbogbo ogun ọrun ni yoo tẹle. "Ọmọ eniyan yoo wa ninu ogo Rẹ, ati gbogbo awọn angẹli mimọ Rẹ pẹlu Rẹ." Matiu 25:31. "Yoo si ran awọn angẹli Rẹ pẹlu ohùn kàkàkí nla, wọn o si ko gbogbo awọn ayanfẹ Rẹ jọ." Matiu 24:31.

Ni igba wiwa Rẹ, a yoo ji awọn olododo ti wọn ti ku dide, a o si pa awọn olododo ti wọn wa laaye lara da. "Kii ṣe gbogbo wa ni yoo sun," ni Pọlu wi, "ṣugbọn a o pa wa lara da, lọgan ni iṣẹju àaya, ni akoko ìpè ikẹyin: nitori kakaki yoo dun, a o si ji awọn oku dide ni aidibajẹ, a o si pa wa lara da. Nitori idibajẹ yii yoo gbe aidibajẹ wọ, ati ara kiku yii yoo si gbe aiku wọ." I Kọrintin 15:51—53. Bakan naa ninu lẹta rẹ si awọn ara Tẹsalonika, lẹyin ti o ṣe alaye wiwa Oluwa, o sọ pe: "Awọn oku ninu Kristi ni yoo kọ jinde: nigba naa ni awa ti a wa laaye, ti o ku yoo lọ pade wọn ninu ikuuku awọsanma, lati pade Oluwa ninu afẹfẹ: bayii ni a o si maa wa lọdọ Oluwa titi lae." I Tẹsalonika 4:16, 17.

O di igba ti Kristi ba wa funra Rẹ ki awọn eniyan Rẹ to le gba ijọba naa. Olugbala wipe: "Nigba ti Ọmọ eniyan yoo yọ ninu ogo Rẹ, ati gbogbo awọn angẹli mimọ Rẹ pẹlu Rẹ, nigba naa ni yoo joko lori itẹ ogo Rẹ: gbogbo awọn orilẹ ede yoo si pejọ siwaju Rẹ: yoo si pin wọn niya gẹgẹ bi oluṣọ aguntan ti n pin aguntan ati ewurẹ niya: yoo si ko awọn aguntan si ọwọ ọtun Rẹ, ati awọn ewurẹ si ọwọ osi. Nigba naa ni Ọba yoo sọ fun awọn ti wọn wa ni ọwọ ọtun rẹ wipe, Ẹ wa ẹyin alabunkun Baba Mi, ki ẹ jogun ijọba ti a ti pese fun yin lati ipilẹṣẹ aye wa." Matiu 25:31—34. A ti ri lati inu ẹṣẹ Iwe Mimọ ti a ka wipe nigba ti Ọmọ eniyan ba wa, a o ji awọn oku dide ni aidibajẹ a o si pa awọn ti wọn wa laaye larada. Nipasẹ ayipada nla yii, a pese wọn silẹ lati

gba ijọba naa; nitori Pọlu sọ wipe: "Ẹran ara ati ẹjẹ ko le jogun ijọba Ọlọrun; nitori idibajẹ ko le jogun aidibajẹ." I Kọrintin 15:50. Ninu ipo ti eniyan wa loni, o le ku, o si ti dibajẹ; ṣugbọn ijọba Ọlọrun ko le dibajẹ, o wà titi lae. Nitori naa eniyan ko le wọ ijọba Ọlọrun ninu ipo ti o wa bayii. Ṣugbọn nigba ti Jesu ba de, yoo fun awọn eniyan Rẹ ni aiku; nigba naa ni yoo pe wọn lati jogun ijọba eyi ti wọn ti jẹ ajogun rẹ ki o to di akoko yii.

Awọn wọnyi ati awọn ẹsẹ miran ṣe alaye rẹ fun Miller yekeyeke wipe awọn iṣẹlẹ ti a n reti wipe yoo ṣaaju wiwa Kristi, bii iṣakoso alaafia ni gbogbo aye ati fifi idi ijọba Ọlọrun mulẹ lori aye, yoo tẹle bibọ lẹẹkeji ni. Siwaju si, gbogbo awọn ami akoko ati ipo ti aye wa bá alaye isọtẹlẹ nipa awọn ọjọ ikẹyin mu. O di dandan fun lati gba, nitori ẹkọ Bibeli nikan, wipe akoko ti a ya sọtọ fun aye yii lati tẹsiwaju ti fẹrẹ pari.

O sọ pe, "Ẹri miran ti o yamilẹnu pupọpupọ ni itọlẹsẹẹsẹ akoko ninu Iwe Mimọ. . . . Mo ri wipe awọn iṣẹlẹ ti a ṣe asọtẹlẹ wọn, ti wọn si ti ṣẹlẹ lati ẹyin wa ṣẹlẹ laarin akoko kan pato. Ọgọfa ọdun ṣaaju ikun omi (Jẹnẹsisi 6:3); ọjọ meje ti yoo ṣaaju rẹ, pẹlu ogoji ọjọ ti òjò yoo fi rọ (Jẹnẹsisi 7:4); irinwo ọdun ti iru ọmọ Abrahamu a fi ṣe atipo (Jẹnẹsisi 15:13); ọjọ mẹta ti ala agbọti ati alase (Jẹnẹsisi 40:12—20); ọdun meje ti ala Farao (Jẹnẹsisi 41:28—54); ogoji ọdun ninu aginju (Numeri 14:34); ìyàn fun ọdun mẹta ati abọ (I Awọn Ọba 17:11) [wo Luku 4:25]; . . . igbekun fun aadọrin ọdun (Jeremaya 25:11); igba meje ti Nebukadnesa (Daniẹl 4:13—16); ati ọsẹ meji, ati ọgọta o le meji ọsẹ, ati ọsẹ kan, ti o jẹ aadọrin ọsẹ papọ ti a pinnu fun awọn Ju (Danieli 9:24—27),—awọn iṣẹlẹ ti a fi akoko ká mọ fi igba kan jẹ asọtẹlẹ, wọn si wa si imuṣẹ gẹgẹ bi a ti sọ wọn."

Nitori naa, nigba ti o ri ọpọlọpọ ilakalẹ akoko bayii ninu ẹkọ Bibeli rẹ, ti wọn si lọ de akoko ipadabọ lẹẹkeji, gẹgẹ bi o ti ye si, ko si ohun ti o le ṣe ju ki o ka wọn si "awọn akoko ti a ti yan tẹlẹ," eyi ti Ọlọrun ti fihan awọn iranṣẹ Rẹ. Mose sọ wipe, "Ohun ikọkọ jẹ ti Oluwa Ọlọrun wa: ṣugbọn awọn nnkan wọnni ti a fihan jẹ ti ti wa ati ti awọn ọmọ wa lae;" Oluwa tun kede nipasẹ woli Amosi wipe Oun "ko ni ṣe ohun kan, ṣugbọn yoo fi aṣiri Rẹ han awọn woli iranṣẹ Rẹ." Diutaronomi 29:29; Amosi 3:7. Nitori naa, awọn akẹkọ ọrọ Ọlọrun le fi igboya reti iṣẹlẹ nla ti o tobi julọ lati ṣẹlẹ ninu itan eniyan, ti a fihan kedere ninu Iwe otitọ.

Miller sọ wipe, "Bi mo ti ni igbagbọ kikun wipe gbogbo Iwe Mimọ ni a fifunni nipa imisi, o si wulo (2 Timoti 3:16); wipe ko wá ni igba kan ri nipa ifẹ eniyan, ṣugbọn awọn eniyan mimọ ni wọn kọ ọ bi Ẹmi Mimọ ti mi si wọn (2 Peteru 1:21), ati pe a kọ ọ fun 'ikọni wa, ki awa, nipasẹ suuru ati itunu Iwe Mimọ le ni ireti' (Romu 15:4), mi o le ṣe ju

ki n ri awọn abala ti wọn sọ nipa itọlẹsẹẹsẹ akoko ninu Bibeli gẹgẹ bi ara ọrọ Ọlọrun, nitori naa, wọn nilo afiyesi tọkantọkan gẹgẹ bi awọn abala Iwe Mimọ miran. Nitori naa, mo ri wipe ni ṣiṣa ipa lati ni oye ohun ti Ọlọrun ri wipe o yẹ ki Oun fihan ninu aanu Rẹ, mi o ni aṣẹ lati ré awọn akoko isọtẹlẹ koja."

Akoko isọtẹlẹ ti o dabi ẹnipe o ṣe afihan kedere akoko ipadabọ lẹẹkeji eyi ti o wa ninu Danieli 8:14: "Titi di ẹgbẹrun meji le ọọdunrun (2300) ọjọ; nigba naa ni a o ya ibi mimọ si mimọ." Ni titẹle ilana fifi Iwe Mimọ ṣe olutumọ ara rẹ, Miller kẹkọ wipe ọjọ kan ninu asọtẹlẹ ti a lo akajuwe fun tumọ si ọdun kan (Numeri 14:34; Isikieli 4:6); o ri wipe 2300 ọjọ ninu asọtẹlẹ, tabi iye ọdun bẹẹ, yoo gun jinna réré koja asiko awọn Ju, nitori naa, ko le jẹ ibi mimọ ti akoko naa. Miller gbagbọ ninu igbagbọ ti o wọpọ nigba naa wipe aye ni ibi mimọ ni akoko Kristẹni, nitori naa, o ni oye wipe yiya ibi mimọ si mimọ ni Danieli 8:14 ṣe afihan fifọ aye mọ pẹlu ina ni igba wiwa Kristi lẹẹkeji. Nitori naa, bi a ba le mọ ibẹrẹ ti o tọna fun 2300 ọjọ, o sọ wipe, a yoo le mọ ni kiakia igba ipadabọ lẹẹkeji. Bayii ni a o ṣe fi akoko imudopin nla naa han, akoko ti a yoo mu ohun gbogbo ti akoko yii, pẹlu "gbogbo igberaga, iwuga ati asan, iwa ika ati ijẹniniya rẹ, yoo wa si opin;" nigba ti a yoo "mu ẹgan kuro lori ilẹ aye, a yoo pa iku run, a o fi èrè fun awọn iranṣẹ Ọlọrun, awọn woli, ẹni mimọ, ati awọn ti wọn bẹru orukọ Rẹ, ti a o si pa awọn ti n pa aye run run."

Pẹlu ifọkansin tuntun ti o jinlẹ si, Miller tẹsiwaju ninu ayẹwo awọn asọtẹlẹ, tosan toru ni o fi jin fun kikẹkọ ohun ti o wa dabi ẹnipe o ṣe pataki si jọjọ, ti o si n gba gbogbo ifẹ ọkan rẹ. Ni ori kejọ iwe Danieli, ko ri ohun ti o le fi mọ ibẹrẹ 2300 ọjọ; bi o tilẹ jẹ wipe a paṣẹ fun angẹli Geburẹli lati jẹ ki iran naa o ye Danieli, alaye apa kan ni o fun un. Bi a ti n fi iran inunibini nla ti yoo de ba ijọ han woli naa, aarẹ mu. Ko le fi ara da a mọ, angẹli naa fi silẹ fun igba kan. Danieli "daku, o si ṣe aarẹ fun ọjọ diẹ." O sọ pe, "Iran naa yami lẹnu, ṣugbọn ko ye ẹnikankan."

Sibẹ Ọlọrun ti paṣẹ fun iranṣẹ Rẹ: "Mu ki ọkunrin yii o ni oye iran naa." A nilati mu aṣẹ naa ṣẹ. Ni igbọran si, angẹli naa, lẹyin igba diẹ pada tọ Danieli wa, o wipe: "Mo wa lati fun ọ ni ọgbọn ati oye;" "nitori naa jẹ ki ọrọ naa ki o ye ọ, ki o si wòye iran naa." Danieli 8:27, 16; 9:22, 23, 25—27. Koko ọrọ pataki kan wa ninu iran ori kejọ ti a koi tii ṣalaye, iyẹn ni eyi ti o ni i ṣe pẹlu akoko—akoko 2300 ọjọ; nitori eyi, angẹli naa, nigba ti o pada sinu alaye rẹ, tẹnumọ koko ọrọ nipa akoko pupọpupọ:

"Aadọrin ọsẹ ni a pinnu fun awọn eniyan rẹ, ati sori Ilu Mimọ rẹ. . . . Nitori naa, mọ ki o si ye ọ wipe lati jijade lọ aṣẹ lati mu Jerusalẹmu bọ sipo ati lati tun un kọ titi di akoko Mesaya Ọmọ alade, yoo jẹ ọsẹ

meje ati ọsẹ mejilelọgọta: a yoo tun igboro ati odi rẹ ṣe, ani ni akoko wahala. Lẹyin ọsẹ mejilelọgọta, a yoo ge Mesaya kuro, ṣugbọn ki i ṣe fun ara Rẹ. . . . Yoo si fi idi majẹmu naa mulẹ pẹlu ọpọlọpọ fun ọsẹ kan; laarin ọsẹ naa, yoo mu ki irubọ ati ọrẹ ẹbọ o wa si opin."

A ran angẹli naa wa nitori ati lè ṣe alaye koko ọrọ ti ko ye ninu iran ori kẹjọ, ọrọ ti o ni i ṣe pẹlu akoko—"titi fi di 2300 ọjọ; lẹyin naa ni a o ya ibi mimọ si mimọ." Lẹyin ti o ti sọ fun Daniẹli "lati ni oye ọrọ naa, ki o si wòye iran naa," awọn ọrọ akọkọ ti angẹli naa sọ ni wipe: "Aadọrin ọsẹ ni a ti pinu sori awọn eniyan rẹ ati sori Ilu Mimọ rẹ." Ọrọ ti a tumọ si pinnu ni o tumọ si "ké kuro." Aadọrin ọsẹ, ti o duro fun ẹẹdẹgbẹta o din mẹwa (490) ọdun, ni angẹli naa sọ wipe a gé kuro ni o ni i ṣe pẹlu awọn Ju ni ọna pataki. Ṣugbọn nibo ni a o ti gé wọn kuro? Niwọn igba ti o jẹ wipe 2300 ọjọ ni akoko kan ṣoṣo ti a mẹnuba ni ẹsẹ ikẹjọ, o gbọdọ jẹ wipe lati ara akoko naa ni a o ti gé aadọrin ọsẹ kuro; nitori naa aadọrin ọsẹ nilati jẹ ara 2300 ọjọ, ti akoko mejeeji naa si nilati bẹrẹ papọ. Angẹli naa sọ pe, aadọrin ọsẹ naa yoo bẹrẹ lati jijade lọ aṣẹ lati mu Jerusalẹmu bọ sipo ati lati tun un kọ. Bi a ba le mọ ọjọ ti a pa aṣẹ yii, a yoo le mọ ibẹrẹ akoko nla ti 2300 ọjọ.

A ri aṣẹ naa ninu ori keje iwe Ẹsra. Ẹsẹ 12-26. Ọba Artaxerxes ni o pa aṣẹ naa ni ọna ti o peye julọ ni 457 B.C. Ṣugbọn ni Ẹsra 6:14, a sọ wipe a kọ ibi mimọ ni Jerusalẹmu "gẹgẹ bi aṣẹ ["ofin"] Cyrus, ati Dariusi, ati Artaxerxes ọba Persia." Awọn ọba mẹtẹẹta wọnyi, ní pipa aṣẹ yii, ni titun pa, ati ni pipari rẹ, fun ni awọn ohun ti asọtẹlẹ nilo lati bẹrẹ 2300 ọjọ. Bi a ba fi 457 B.C, nigba ti aṣẹ yii jade ni kikun ṣe ọjọ ti a pa aṣẹ yii, gbogbo alaye nipa asọtẹlẹ ti aadọrin ọsẹ ni a o ri wipe wọn ti wa si imuṣẹ.

"Lati igba jijadelọ aṣẹ lati tun Jerusalẹmu kọ titi di igba Mesaya Ọmọ Alade yoo jẹ ọsẹ meje ati ọgọta o le meji"—eyi ni ọsẹ mọkandinlaadọrin tabi 483 ọdun. Aṣẹ Artaxerxes bẹrẹ iṣẹ ni akoko ìkórè ni ọdun 457 B. C. Bẹrẹ lati ọjọ yii, 483 ọdun lọ dé akoko ikore A. D. 27. Ni akoko naa, asọtẹlẹ yii wa si imuṣẹ. Ọrọ ti n jẹ "Mesaya" tumọ si "Ẹni Ami òróró." Ni akoko ikore A. D. 27, Johanu ri Kristi bọmi, O si gba ifami ororo yan ti Ẹmi. Apostoli jẹri wipe "Ọlọrun fi ami ororo yan Jesu pẹlu Ẹmi Mimọ ati agbara." Iṣe 10:38. Olugbala funra Rẹ kede wipe: "Ẹmi Oluwa n bẹ lara Mi, nitori ti O ti fi ami ororo yan Mi lati waasu iyinrere fun awọn otoṣi." Luku 4: 18. Lẹyin itẹbọmi Rẹ, O lọ si Galili "O n waasu iyinrere ijọba Ọlọrun, O n wipe, Akoko naa de." Maku 1:14, 15.

"Yoo si fi idi majẹmu naa mulẹ pẹlu ọpọlọpọ fun ọsẹ kan." "Ọsẹ" ti a n sọ nibi ni ọsẹ ti o kẹyin ninu aadọrin ọsẹ; ọdun meje ti o kẹyin

ninu akoko ti a lakalẹ fun awọn Ju. Ni aarin akoko yii, ti o bẹrẹ ni A. D. 27 titi de A. D. 34, Kristi funra Rẹ ni akọkọ, ati lẹyin eyi, nipasẹ awọn ọmọ ẹyin Rẹ fi ipe iyinrere fun awọn Ju ni pataki julọ. Bi awọn apostoli ti n jade lọ pẹlu iroyin ayọ ti ijọba naa, ikilọ Olugbala ni pe: "Ẹ maṣe tọ awọn Keferi lọ, ki ẹ masi ṣe wọ ilu awọn ara Samaria: ṣugbọn ki ẹ lọ si ọdọ awọn aguntan ti o sọnu ni ile Israẹli." Matiu 10:5, 6.

"Ni aarin ọsẹ naa, yoo mu ki ẹbọ ati ọrẹ ẹbọ o wa si opin." Ni A. D. 31, ọdun mẹta aabọ lẹyin itẹbọmi Rẹ, a kan Oluwa wa mọ agbelebu. Pẹlu ẹbọ nla ti a ru ni ori Kalfari, eto isin irubọ ti o n tọka si Ọdọ Aguntan Ọlọrun fun ẹgbẹrun mẹrin ọdun wa si opin. Apejuwe ti pade ohun ti o n tọka si, gbogbo irubọ ati ọrẹ ati eto irubọ imukuro ẹṣẹ ni wọn wa si opin.

Aadọrin ọsẹ tabi 490 ọdun ti a ya sọtọ fun awón Ju pari, gẹgẹ bi a ti ri ni A. D. 34. Ni akoko yii, nipasẹ ipinu Sanhẹndrin awọn Ju, orilẹ ede naa fi edidi di bi o ti ṣe kọ iyinrere silẹ nipa bi o ti ṣe pa Stefanu, ti o si ṣe inunibini si awọn atẹle Kristi. Nigba naa ni iyinrere igbala ki i ti i ṣe fun awọn ti a yan nikan mọ, ti a si fifun araye. Inunibini jẹ ki awọn ọmọ ẹyin o sa kuro ni Jerusalẹmu, wọn si n "waasu ọrọ naa ni ibikibi ti wọn ba lọ." "Filipi lọ si ilu Samaria, o si waasu Kristi fun wọn." Lati ọrun wa, a ran Peteru lati waasu iyinrere fun Kọneliu, olubẹru Ọlọrun; a si jere Pọlu alagidi sinu igbagbọ Kristi, a fun ni ojuṣe lati gbe iroyin ayọ naa "jinna réré lọ si ọdọ awọn Keferi." Iṣe 8:4, 5; 22:21.

Gbogbo apejuwe inu asọtẹlẹ ni wọn wa si imuṣẹ ręgirẹgi titi débí, laiṣeyemeji, a fi idi ibẹrẹ aadọrin ọsẹ mulẹ si 457 B. C., o si pari ni A. D. 34. Lati inu alaye yii, ko nira lati mọ opin 2300 ọjọ. Nigba ti a gé aadọrin ọsẹ—490 ọjọ—kuro ninu 2300, 1810 ọjọ ni ti o ku silẹ. Lẹyin opin 490 ọjọ, 1810 ọjọ koi tii wa si imuṣẹ. Lati A. D. 34, 1810 ọdun pari si 1844. Nitori naa, 2300 ọjọ ti inu Danięli 8:14 pari si 1844. Ni opin akoko nla ti a sọtẹlẹ yii, lori ẹri angẹli Ọlọrun, "a o ṣe iwẹnumọ ibi mimọ." Bayii ni a ṣe fi akoko ti a o ṣe iwẹnumọ ibi mimọ—eyi ti ọpọlọpọ eniyan gba wipe yoo ṣẹlẹ ni akoko wiwa lęękeji—hàn kedere.

Miller ati awọn akẹgbẹ rẹ kọkọ gbagbọ wipe 2300 ọjọ yoo pari ni igba ọgbin ni 1844, ṣugbọn asọtẹlẹ tọka si akoko ikore ọdun naa. Iṣitumọ abala yii kó ijakulẹ ati iporuuru ọkan ba awọn ti wọn ti yan ọjọ yii gẹgẹ bi akoko wiwa Oluwa. Ṣugbọn eyi ko din agbara iṣọwọsọrọ wọn ku, eyi ti o fihan wipe 2300 pari ni 1844, ati pe iṣẹlẹ nla ti a ṣe afihan rẹ ni ṣiṣe iwẹnumọ ibi mimọ yoo ṣẹlẹ.

Ni kikọ ẹkọ Bibeli bi o ti n ṣe, lati le fihan wipe wọn jẹ ifihan lati ọdọ Ọlọrun, Miller, lati ibẹrẹ wa, ko ni ero lati ri koko ọrọ ti o ri yii. Oun funra rẹ ko le dede fi ọwọ sọya lori ayọrisi ikẹkọ rẹ. Ṣugbọn ẹri lati inu Bibeli han kedere o si lagbara ju ohun ti a le ti si ẹgbẹ kan lọ.

Ọdun meji ni o fi jin fun ẹkọ Bibeli, ni 1818, nigba ti o ri aridaju wipe nibii ọdun marundinlọgbọn si akoko yii, Kristi yoo wa fun irapada awọn eniyan Rẹ, Miller sọ wipe, "Mi o nilo lati sọ iru ayọ ti o kun ọkan mi nitori iṣẹlẹ alayọ yii, tabi iṣọna gbigbona ọkan mi lati kopa ninu ayọ awọn ti a rapada. Bibeli wa di iwe tuntun fun mi. Nitootọ, o jẹ ibi àsè fun ironu; gbogbo ohun ti o ṣokunkun, ti ko yeni tabi ti o farasin ninu ikọni rẹ ni wọn kuro ninu ọkan mi nitori imọlẹ ti ó wa yọ lati inu oju ewé mimọ rẹ wa; ah! bawo ni otitọ rẹ ti mọlẹ to, ti o si logo to! Gbogbo itakora ati aidọgba ti mo ri ninu rẹ tẹlẹ ti lọ; lootọ ọpọ awọn abala ni oye wọn ko tẹmilọrun to, sibẹ imọlẹ ti o pọ tan jade lati inu rẹ lati tan imọlẹ si iye mi ti o ṣokunkun tẹlẹ, ti mo fi ni inudidun ni kikọ ẹkọ Iwe Mimọ ti emi ko lero tẹlẹ wipe a le ri ninu awọn ikọni rẹ."

"Pẹlu igbagbọ wipe a ṣe isọtẹlẹ iru iṣẹlẹ nla bayii ninu Iwe Mimọ, ti yoo ṣẹlẹ ni akoko diẹ si igba ti a wa yii, ibeere wa si ọkan mi pẹlu agbara nla ti o sọ nipa ojuṣe mi si araye latari ẹri ti wọn nipa lori ọkan mi." Ko le ṣe ki o ma ro wipe ojuṣe oun ni lati tan imọlẹ ti oun ti gba si awọn miran. O reti lati ni atako lati ọdọ awọn alaiwabiọlọrun, ṣugbọn o ni igboya wipe gbogbo Kristẹni ni yoo yọ ninu ireti lati pade Olugbala ti wọn sọ wipe wọn fẹran. Ibẹru kan ṣoṣo ti o ni ni wipe, ninu ayọ nla wọn fun ireti idande ologo, eyi ti yoo wa si imuṣẹ laipẹ, ọpọlọpọ ni yoo gba ikọni naa laiṣe ayẹwo Iwe Mimọ finifini lati mọ boya o jẹ ootọ. Nitori naa, o lọra lati kede rẹ, ki o ma ba wa ninu aṣiṣe, ki o masi ṣe ṣi awọn miran lọna. Bayii ni o ṣe ṣe atunyẹwo awọn ẹri ti wọn kin awari rẹ lẹyin, ti o si wo gbogbo iṣoro ti wọn ba wa si lọkan finifini. O ri wipe awọn ibeere naa poora niwaju imọlẹ ọrọ Ọlọrun, bii kurukuru tii ṣe niwaju oorun. Ọdun marun ni o fi ṣe awọn ohun ti wọn jẹ ki o gbagbọ wipe igbagbọ oun tọna.

Bayi, ojuṣe lati sọ igbagbọ rẹ fun awọn miran, ti Bibeli fi kọni ni kedere wa kun lọkan pẹlu agbara lakọtun. O sọ pe, "Nigba ti mo ba n ṣe iṣẹ mi, o n ro gbọmọgbọmọ ni eti mi pe, 'Lọ ki o si sọ fun araye nipa inu ewu ti wọn wa.' Ẹsẹ yii saba maa n wa si ọkan mi: 'Nigba ti mo ba sọ fun ẹlẹṣẹ, A! iwọ eniyan buburu, kiku ni iwọ yoo ku; bi iwọ ko ba sọrọ lati ṣe ikilọ fun ẹlẹṣẹ kuro ninu ọna rẹ, ẹlẹṣẹ naa yoo kú ninu aiṣedeede rẹ; ṣugbọn ẹjẹ rẹ ni Emi yoo beere lọwọ rẹ. Ṣugbọn bi o ba kilọ fun ẹlẹṣẹ lati yipada kuro ninu ọna rẹ, yoo ku ninu aiṣedeede rẹ, ṣugbọn iwọ ti gba ọkan rẹ la.' Isikiẹli 33:8, 9. Mo mọ wipe bi a ba le kilọ fun awọn eniyan buburu daradara, ọpọlọpọ wọn ni yoo ronupiwada, ati pe bi mi o ba kilọ fun wọn, a o beere ẹjẹ wọn ni ọwọ mi."

O bẹrẹ si nii sọ ohun ti o gbagbọ fun awọn eniyan lọkọọkan nigba ti o ba ri anfani, ti o si n gbadura ki awọn alufa diẹ baa le ni imọlara agbara wọn, ki wọn si fi ara wọn jin fun wiwaasu rẹ. Ṣugbọn ko le mu

igbagbọ wipe oun ni ojuṣe lati fun awọn eniyan ni ikilọ kuro. Awọn ọrọ wọnyi saba maa n sọ si lọkan: “Lọ sọ fun araye; ẹjẹ wọn ni Emi yoo beere lọwọ rẹ.” Fun ọdun mẹsan, o duro, ti ẹru naa si wọ ọ lọkan, titi di 1831, nigba ti o sọ awọn ìdí fun igbagbọ rẹ ni igba akọkọ.

Gẹgẹ bi a ti pe Eliṣa lati ibi ti o ti n tẹle malu ninu oko, lati gba agbada iyasimimọ si ipo woli, bẹẹ gẹgẹ ni a pe William Miller lati kuro ni idi ohun ti o fi n ṣiṣẹ oko lati waasu awọn ohun ijinlẹ ijọba ọrun si awọn eniyan. O bẹrẹ iṣẹ rẹ pẹlu iwariri, o dari awọn olugbọ rẹ lẹsẹẹsẹ ninu awọn akoko isọtẹlẹ titi de ifarahan lẹẹkeji Kristi. Pẹlu gbogbo akitiyan o ni okun ati igboya bi o ti ri ti ifẹ fun ọrọ rẹ n gbilẹ si.

Nitori ipẹ awọn arakunrin rẹ, ninu eyi ti o ti gbọ ipe Ọlọrun, ni Miller fi gba lati sọ igbagbọ rẹ ni gbangba. Bayii o ti pe ọmọ aadọta ọdun, ko mọ bi wọn ti n sọrọ ni ita gbangba, aikunju osuwọn fun iṣẹ ti o wa niwaju rẹ si di ẹru wọ ọ lọrun. Ṣugbọn lati ibẹrẹ wa, a bukun iṣẹ rẹ pẹlu igbala awọn eniyan. Ẹkọ rẹ akọkọ fa isọji ninu ẹsin, ninu eyi ti idile mẹtala ronupiwada, ti o si ku eniyan meji silẹ. Lọgan ni a rọ ọ lati sọrọ ni awọn ibomiran, ati pe o fẹrẹ jẹ wipe ni ibi gbogbo, iṣẹ rẹ saba maa n yọri si isọji ninu iṣẹ Ọlọrun. Awọn ẹlẹṣẹ n yipada, awọn Kristẹni n jọwọ ara wọn silẹ fun iṣẹ Ọlọrun si, awọn ti wọn gbagbọ wipe Ọlọrun ko naani aye yii mọ ati awọn alaigbagbọ gba otitọ Bibeli ati ẹsin Kristẹni gbọ. Ẹri awọn ti o ṣiṣẹ laarin wọn ni wipe: “O de ọdọ awọn eniyan kan ti ẹlomiran ko le de.” O ṣe iwaasu rẹ lati ta iye awọn eniyan ji si ohun nla ti ẹsin ati lati da ifẹ aye ati ifẹkufẹ ara ti akoko naa duro.

O fẹrẹ jẹ wipe ni gbogbo ilu ti o lọ ọpọlọpọ eniyan, ni ibomiran, ni ọgọrọọrun, ni wọn yipada latari iwaasu rẹ. Ni ọpọlọpọ ilu wọn ṣi ilẹkun ile ijọsin awọn Protestant silẹ fun laika ijọ wọn si, ti iwe ipe lati ṣiṣẹ si n wa ni pataki julọ lati ọdọ awọn alufa ijọ miran. O jẹ ipinu rẹ lati maṣe ṣiṣẹ nibi ti a ko ba ti pe e, sibẹ ko pẹ ti o fi ri wipe oun ko le dahun si aabọ ninu awọn iwe ipe ti wọn fun un. Ọpọ awọn ti ko gbagbọ ninu ero rẹ nipa igba gan ni pato fun ipadabọ lẹẹkeji ni igbagbọ wipe nitootọ, Kristi n bọ wa ati wipe, o sunmọle ati wipe wọn nilo imurasilẹ. Ninu awọn ilu miran, iṣẹ rẹ ni awọn ami ti o yatọ. Awọn ti n ta ọti fi ọja wọn silẹ ti wọn si sọ ibi itaja wọn di ile ipade; a tu awọn ibi ti a ti n ta tẹtẹ ka; awọn alaigbagbọ ati awọn ti wọn gbagbọ wipe Ọlọrun ko naani aye mọ, awọn ti wọn gbagbọ wipe gbogbo eniyan ni a o gbala, ani ati awọn ti wọn buru julọ ni wọn ṣe atunṣe, diẹ ninu wọn ni o jẹ wipe wọn koi tii wọ inu ile ijọsin fun ọjọ pipẹ. Orișiriși awọn ile ijọsin dá ipade adura silẹ ni ibi gbogbo, fun bi aarin wakati kọọkan, awọn onișowo a pejọ pọ ni ọsan fun adura ati isin. Ko si ariwo ti ko nitumọ, ṣugbọn gbogbo awọn eniyan ni wọn wa ni idakẹjẹ tọwọtọwọ. Iṣẹ rẹ, bii ti awọn Alatunṣe iṣaaju, jẹ lati ṣi

eniyan loye ki o si pe ẹri ọkan si ojuṣe rẹ, kii kan i ṣe lati ru ẹmi awọn eniyan soke nikan lasan.

Ni 1833 Miller gba iwe aṣẹ lati waasu lati ọdọ ijọ Baptist, ọmọ ijọ eyi ti o n ṣe. Ọpọ awọn alufa inu ijọ rẹ naa ni wọn fi ọwọ si iṣẹ rẹ, o si tẹsiwaju ninu awọn akitiyan rẹ nitori pe wọn fi ọwọ si ni ọna ti o ba ofin mu. O rinrinajo, o si waasu laisinmi, bi o tilẹ jẹ wipe laarin New England ati Middle States nikan ni o ti n ṣiṣẹ. Fun ọdun diẹ, owo ara rẹ ni o n ná, ṣugbọn lẹyin eyi, owo ti o n ri ko to lati rin irinajo lọ si ọpọ awọn ibi ti a ti pe e. Nitori naa, iṣẹ itagbangba rẹ, dipo ki o ṣọ ọ di ọlọrọ, o gba awọn ohun ini rẹ ti o rọra n dinku si ni ní akoko igbe aye rẹ yii. Idile rẹ pọ, ṣugbọn nitori pe wọn n mura siṣẹ, wọn si n ṣọwo na, oko rẹ to gbogbo wọn jẹ.

Ni 1833, ọdun meji lẹyin ti Miller bẹrẹ si ni ṣe alaye awọn ẹri fun wiwa Kristi laipẹ ni ita gbangba, ami ti o kẹyin, eyi ti Olugbala ṣeleri gẹgẹ bi ami wiwa Rẹ lẹẹkeji, fi ara han. Jesu sọ pe: “Awọn irawọ yoo jabọ lati oju ọrun.” Matiu 24:29. Johanu ninu iwe Ifihan, bi o ti n wo awọn iran iṣẹlẹ ti yoo ṣaaju ọjọ Ọlọrun sọ wipe: “Awọn irawọ ọrun jabọ si aye, ani bi igi ọpọtọ ti i rẹ eso rẹ ti koi tii gbo nigba ti afẹfẹ nla mi i.” Ifihan 6:13. Asọtẹlẹ yii ni imuṣẹ ti o lagbara ti o si banilẹru ninu awọn “irawọ ti wọn jabọ ni November 13, 1833. Eyi ni iṣẹlẹ irawọ ti o jabọ ti o pọ ti o si yanilẹnu julọ ninu itan; “oju ọrun, ni gbogbo United Sates, fun wakati diẹ, kun fun idarudapọ imọlẹ! Ko si iru iṣẹlẹ oju ọrun bẹẹ ti o ti ṣẹlẹ ri ni orilẹ ede yii, lati igba ti a ti tẹdo si ori rẹ, awọn ẹgbẹ kan ni ilu fi tiyanutiyanu wo o, awọn miran si n fi tibẹrutibẹru wo o.” “Ọla ati iyanu ẹwa rẹ si wa ni iranti ọpọ eniyan. . . . Ojo koi tii rọ pupọ to bi irawọ ti rọ sori ilẹ aye; ila oorun, iwo oorun, ariwa ati gusu, bakan naa ni o ri. Ni ọrọ kan o dabi ẹnipe gbogbo oju ọrun n yi biri. . . . Iṣẹlẹ naa, bi Professor Silliman ti ṣe alaye rẹ ninu Journal ni a ri ni gbogbo North America. . . . Lati ago meji titi fi di oju mọnmọn, ko si ikuuku tabi idarudapọ loju awọsanma, imọlẹ ti n dan n fi ara han ni oju ọrun.”

“Nitootọ, ko si ede kan ti o le ṣe alaye didan iṣẹlẹ ogo naa; . . . ẹni ti ko ri ko le mọ bi ogo rẹ ti pọ to. O dabi ẹnipe gbogbo irawọ oju ọrun ko ara wọn jọ pọ si oju kan naa ni oke, wọn wa n jumọ jabọ papọ, pẹlu ìyára mọnamọna, si gbogbo oju ilẹ; sibẹ, wọn ko tan—ẹgbẹẹgbẹrun ni wọn n tẹle ipasẹ ẹgbẹẹgbẹrun, ayafi bi ẹnipe nitori bẹẹ ni a ṣe da wọn.” “Iṣẹlẹ ti o dabi igi ọpọtọ ti n rẹ eso rẹ nigba ti afẹfẹ nla ba fẹ lu u ni lootọ, ko ṣe e ṣe lati wo o.”

Ninu New York Journal of Commerce ti November 14, 1833, ayọka gigun kan wa ti o sọ nipa iṣẹlẹ agbayanu yii, o sọ pe: “Ko si alarojinlẹ tabi ọmọwe ti o tii sọ tabi kọ iru iṣẹlẹ bii ti eyi ti o ṣẹlẹ ni aarọ àná

yẹn silẹ. Woli kan, fun 1800 ọdun sẹyin sọ ọ tẹlẹ gẹẹlẹ, bi a ba maa ni iṣoro lati mọ wipe irawọ ti o n jabọ tumọ si jijabọ irawọ, . . . ni ọna ti o gba ṣẹlẹ yii nikan ni o fi le jẹ ootọ.”

Bayii ni eyi ti o kẹyin ninu awọn aami wiwa rẹ, nipa eyi ti Jesu sọ fun awọn ọmọ ẹyin Rẹ ṣe fi ara han: “Nigba ti ẹyin ba ri awọn nnkan wọnyi, mo wipe o sunmọle, ani lẹnu ilẹkun.” Matiu 24:23. Lẹyin awọn aami wọnyi, Johanu kiyesi, gẹgẹ bi iṣẹlẹ nla ti o tẹle, awọn ọrun n ṣi gẹgẹ bi iwe, nigba ti ilẹ n ri, oke ati awọn erekuṣu n kuro ni ipo wọn, ti awọn ẹni buburu, nitori ẹru, n wa ọna lati sa kuro niwaju Ọmọ eniyan. Ifihan 6:12—17.

Ọpọlọpọ awọn ti wọn ri irawọ ti n jabọ wo o gẹgẹ bi akede idajọ ti n bọ, “apẹẹrẹ ti o banilẹru, atọna ti o daju, aami aanu, fun ọjọ nla ti o lẹru.” Bayi ni a ṣe dari akiyesi awọn eniyan si imuṣẹ asọtẹlẹ, eyi si jẹ ki ọpọlọpọ o tẹti si ikilọ nipa ipadabọ lẹẹkeji.

Ni ọdun 1840, imuṣẹ asọtẹlẹ ni ọna ti o yanilẹnu julọ tun jẹ ki ifẹ awọn eniyan o ru soke si. Ni ọdun meji ṣaaju, Josiah Litch, ọkan ninu awọn aṣaaju oniwaasu ti n kede ipadabọ lẹẹkeji, tẹ iwe kan jade nipa iwe Ifihan ori kẹsan, o sọ asọtẹlẹ nipa iṣubu Ottoman Empire. Gẹgẹ bi iṣiro rẹ ti sọ, a o bi agbara yii lulẹ ni A. D. 1840, ni akoko kan ninu oṣu kẹjọ;” ni ọjọ diẹ ṣaaju imuṣẹ rẹ, o kọwe wipe: “Bi a ba gba wipe abala akoko, 150 ọdun, wa si imuṣe daradara ki Deacozes to gun ori itẹ nipa aṣẹ awọn Turk, ati wipe ọdun 391 ati ọjọ marundinlogun, bẹrẹ ni opin abala akoko yii, yoo pari ni ọjọ kọkanla oṣu kẹjọ, 1840 nigba ti a n reti ki agbara Ottoman ni Consantinople o fọ. Eyi ni mo gbagbọ wipe yoo ṣẹlẹ.”

Ni akoko ti a tọka si yii gan, Turkey nipasẹ aṣoju rẹ, gba idaabobo akojọpọ agbara Europe, bayii ni o ṣe fi ara rẹ si abẹ aabo awọn orilẹ ede Kristẹni. Iṣẹlẹ yii mu ki akọsilẹ naa o wa si imuṣẹ rẹgi. Nigba ti a mọ eyi, ọpọlọpọ ni gbangba sọ wipe ilana ti a fi n tumọ isọtẹlẹ ti Miller ati awọn akẹgbẹ rẹ lo tọna, eyi si fun ẹgbẹ ti n kede ipadabọ lagbara to yanilẹnu. Awọn ọmọwe ati awọn ọtọnkulu ilu darapọ mọ Miller lati waasu ati lati ṣe itẹjade awọn ero rẹ, bayii ni iṣẹ naa ṣe tan kalẹ jọjọ lati 1840 de 1844.

William Miller ni ọpọlọ ti o yè kooro, eyi ti o ni nipasẹ ironu ati ẹkọ; o tun fi ọgbọn ọrun kun eyi nipa siso ara rẹ pọ mọ Orisun ọgbọn. O jẹ olootọ eniyan, ti ko le ma ri ibọwọfun ati ibọlafun awọn eniyan nibikibi ti a ba ti bu ọla fun iṣotitọ ati iwa rere. Ni síso inurere ọkan tootọ pọ pẹlu irẹlẹ Kristẹni ati agbara ikoraẹni-nijanu, o jẹ olutẹtisini ti o tun ṣe e rọrun lati ba sọrọ, o ṣetan lati tẹti si ero awọn miran, ki o si gbé koko ọrọ wọn yẹwo. Laisi igbonara tabi iru-ẹmi-soke, o yẹ gbogbo ero ati ikọni wo pẹlu ọrọ Ọlọrun, iṣọwọronu rẹ ti o ye

kooro ati imọ rẹ ninu Iwe Mimọ si ran an lọwọ lati tako irọ ati lati ṣe afihan èké.

Sibẹ ko ṣe iṣẹ rẹ laisi atako kíkorò. Gẹgẹ bi o ti ṣẹlẹ si awọn Alatunṣe iṣaaju, awọn olukọ ẹsin ti wọn ti di ilumọọka ko fi oju rere wo otitọ ti o n kede. Nigba ti awọn olukọ wọnyi ko le fi Iwe Mimọ gbe ara wọn lẹsẹ, wọn bere si i lo ikọni ati ọrọ eniyan, ikọni awọn Baba ijọ. Ṣugbọn ọrọ Ọlọrun nikanṣoṣo ni ẹri ti oniwaasu otitọ ti ipadabọ gba. "Bibeli, ati Bibeli nikan," ni akọmọna wọn. Nitori ti awọn alatako ko le fi Bibeli gbe ara wọn lẹsẹ, wọn wa n lo ẹgan ati ifinisẹsin. Akoko, ohun ini, ati ẹbun ni a lo lati ṣe ibalorukọjẹ awọn ti o jẹ wipe ẹṣẹ wọn ko ju wipe wọn n wọna fun ipadabọ Oluwa wọn pẹlu ayọ ati pe wọn n gbiyanju lati gbe igbesi aye mimọ, ti wọn si n gba awọn iyoku niyanju lati mura silẹ fun ifarahan Rẹ.

A ṣe iṣẹ takuntakun lati yi ọkan awọn eniyan pada kuro ninu ọrọ nipa ipadabọ lẹẹkeji. A ṣe afihan rẹ bi ẹnipe ẹṣẹ ni, ohun ti o yẹ ki o ti eniyan loju ni lati kọ nipa awọn isọtẹlẹ ti wọn ni i ṣe pẹlu wiwa Kristi ati opin aye. Bayi awọn ijọ ti wọn gbajugbaja ṣe tẹ igbagbọ ninu ọrọ Ọlọrun rì. Ikọni wọn sọ ni di alaigbagbọ, ti ọpọlọpọ si yan lati rin ninu ifẹkufẹ alaiwabiọlọrun wọn. Awọn olupilẹṣẹ iwa buburu si sọ wipe awọn onireti ni wọn fa a.

Nigba ti awọn ọlọgbọn n ṣe atẹlẹ rẹ ti awọn eniyan si ti n fi tọkantọkan tẹti silẹ, orukọ Miller ki i jade ninu iwe ateẹjade awọn ijọ ayafi lati fi ṣe ẹlẹya tabi bi wọn ba fẹ ṣe atako rẹ. Atako awọn olukọ ẹsin ki awọn alaibikita ati alaiwabiọlọrun laya, wọn n lo ọrọ ti ko tọ, awọn awada ti ko yẹ, ti ko pọnnile, ninu akitiyan wọn lati kó iwọsi ba ati iṣẹ rẹ. A fi ẹgan pe, baba agbalagba naa, ti o fi irọrun ile rẹ silẹ lati rin irinajo pẹlu owo ara rẹ lati ilu de ilu, lati ileto de ileto, ti o n ṣiṣẹ laisinmi lati jiṣe ikilọ idajọ ti o sunmọle fun araye, ní elerokero nipa ẹsin, opuro ati ẹlẹtan eniyan.

Ẹsin, irọ ati eebu ti a fi bu jẹ ki awọn ontẹwe ti ki i ṣe ti ẹsin o fesi pẹlu ibinu. "Lati dahun si ọrọ ti o lọla ti o si ni atubọtan ti o lẹru," pẹlu ọwọ yẹpẹrẹ ati awada ni awọn aye kede wipe "kii tilẹ n ṣe wipe o n fi ero awọn ti n kede, ti wọn si n kọni nipa rẹ ṣe ẹfẹ nikan," ṣugbọn "o tumọ si fifi ojọ idajo ṣẹfẹ, fifi Ọlọrun funra Rẹ ṣẹfẹ, ati kikẹgan ẹru ile idajọ Rẹ."

Olupilẹṣẹ gbogbo iwa buburu n wa ọna, ki i ṣe lati ba agbara iwaasu ipadabọ jẹ nikan, ṣugbọn lati pa ojiṣẹ naa funra rẹ. Miller jẹ ki otitọ inu Iwe Mimọ o wọ ọkan awọn olugbọ rẹ lọ, o ba ẹṣẹ wọn wi, o damu itẹraẹnilọrun wọn, awọn ọrọ taara rẹ ti n wọni lọkan si fa ikorira wọn. Atako awọn ọmọ ijọ si iṣẹ iranṣẹ rẹ mu awọn oniwaibajẹ lọkan le lati ṣe ju bẹẹ lọ; awọn ọta pero lati gba ẹmi rẹ nigba ti o fẹ kuro ni ibi

ipade. Ṣugbọn angẹli mimọ pọ nibẹ, ọkan ninu wọn, ninu awọ eniyan fa iranṣẹ Oluwa lọwọ kuro lọwọ ibinu ọpọ ero lọ si ibi aabo. Koi tii pari iṣẹ rẹ, Satani ati awọn aṣoju rẹ si n baku ninu erongba wọn.

Pẹlu gbogbo atako wọnyi, ifẹ awọn eniyan ninu ẹgbẹ ti n kede ipadabọ tubọ n pọ si. Lati bii awọn eniyan diẹ, wọn ti di ẹgbẹlẹgbẹ. Wọn lọ si orișiriși ile ijọsin, ṣugbọn lẹyin igba diẹ, ẹmi atako dide si awọn ti wọn yipada, awọn ijọ si bẹrẹ si ni ba awọn ti wọn gba ero Miller gbọ wi. Iwa yii mu ki o kọwe lati fesi, ninu iwe ti o kọ si gbogbo Kristẹni, o sọ pe bi awọn ikọni oun ba jẹ iro, ki wọn fi aṣiṣe oun han lati inu Iwe Mimọ.

O sọ wipe, “Kini a gbagbọ ti kii ṣe ọrọ Ọlọrun ni o paṣẹ fun wa lati gba a gbọ, eyi ti ẹyin gba wipe ohun ni odiwọn, odiwọn kan ṣoṣo fun igbagbọ ati iṣesi? Kini a ṣe ti o yẹ ki o mu iru ibawi nigbangba bayẹn wa ni atako si wa lati ori pẹpẹ iwaasu ati lati ile itẹwe, ti o tun fun yin ni idi ti o tọ lati yọ wa [awọn Onireti] kuro ninu ijọ ati ibaṣepọ yin?” “Bi a ba ṣe aṣiṣe, ẹ fihan wa nibi ti a ti ṣe e. Ẹ fihan wa lati inu ọrọ Ọlọrun wipe a ṣe aṣiṣe; ifinișẹsin yii ti to; eyi ko le mu wa gbagbọ wipe a ko tọna; ọrọ Ọlọrun nikan ni o le yi igbagbọ wa pada. A ṣe agbekalẹ ohun ti a gbagbọ pẹlu ero ati adura, bi a ti n ri ẹri rẹ lati inu Iwe Mimọ.”

Lati igba de igba iru ẹmi aigbagbọ kan naa ni awọn eniyan fi maa n gba awọn ikilọ ti Ọlọrun ran si aye nipasẹ awọn iranṣẹ Rẹ. Nigba ti ẹṣẹ awọn eniyan ti wọn wa ṣaaju ikun omi mu ki omi o kun ori ilẹ aye, O kọkọ fi erongba Rẹ han wọn, ki wọn baa le ni anfani lati yi kuro ninu ọna buburu wọn. Fun ọgọfa ọdun ni a fi kede ikilọ leti wọn wipe ki wọn ronupiwada, ki ibinu Ọlọrun ma baa wá fun iparun wọn. Ṣugbọn iṣẹ iranṣẹ naa dabi alọ ni eti wọn, wọn ko si gba a gbọ. Wọn ni igboya si ninu iwa buburu wọn, wọn fi iranṣẹ Ọlọrun ṣẹsin, wọn tẹnbẹlu ipẹ rẹ, ani wọn fi ẹsun gbigba nnkan gbọ lainidi kan an. Bawo ni ẹnikan ṣe le duro koju awọn eniyan nla aye? Bi iṣẹ iranṣẹ Noah ba jẹ otitọ, kilode ti gbogbo aye ko fi gba a gbọ? Igbagbọ ẹnikan ni atako si ọgbọn awọn ẹgbẹlẹgbẹ! Wọn ko gba ikilọ naa gbọ, bẹẹ si ni wọn ko wa aabo ninu ọkọ.

Awọn ẹlẹgan tọka si awọn ohun ti a da,—si bi igba ti n lọ ni akoko wọn laiyẹsẹ, si oju ọrun ti koi tii rọjo ri, si papako ti ìrì alẹ n bomi rin,—wọn si kigbe wipe: “Ṣe kii ṣe alọ ni o n pa bi?” Pẹlu ẹgan, wọn kede wipe oniwaasu ododo ti di onitara gbigbona to ti yan ẹhana; wọn si tẹsiwaju si ní wiwa faaji, wọn si mọọmọ rin ni ọna iwa buburu ju ti atijọ lọ. Ṣugbọn aigbagbọ wọn ko di iṣẹlẹ ti a ti sọ tẹlẹ lọwọ. Ọlọrun fi ara da iwa buburu wọn fun igba pipẹ, O n fun wọn ni anfani pupọ fun ironupiwada; ṣugbọn nigba ti akoko to, O bẹ idajọ Rẹ wo lori awọn ti wọn ti kọ aanu Rẹ silẹ.

Kristi sọ wipe iru aigbagbọ kan naa ni awọn eniyan yoo fihan nipa ipadabọ Rẹ lẹẹkeji. Gẹgẹ bi awọn eniyan ni akoko Noah "ko ti mọ titi ti ikun omi fi de, ti o si gba gbogbo wọn lọ; bẹẹ gẹgẹ," ninu ọrọ Olugbala wa, "ni wiwa Ọmọ eniyan yoo ti ri." Matiu 24:39. Nigba ti awọn ti wọn pe ara wọn ni eniyan Ọlọrun ba n darapọ mọ aye, ti wọn n gbe bii ti wọn, ti wọn si n dara pọ mọ wọn ninu faaji ti ko tọ; nigba ti igbadun aye ba di igbadun ijọ; nigba ti agogo igbeyawo ba n dun, ti gbogbo eniyan si n wo ọjọ iwaju fun ọpọ ọrọ aye—nigba naa, lọgan gẹgẹ bi mọnamọna oju ọrun, ni opin yoo de ba iran ologo ati ireti ẹtan wọn.

Bi Ọlọrun ti ran iranṣẹ Rẹ lati kilọ fun araye nipa ikun omi ti o n bọ, bẹẹ gẹgẹ ni O ran awọn iranṣẹ Rẹ ti O yan lati ṣe afihan bi idajọ ti o kẹyin ti sunmọ to. Bi awọn eniyan nigba aye Noah ti kẹgan asọtẹlẹ oniwaasu ododo, bẹẹ gẹgẹ ni akoko Miller ọpọlọpọ, ani awọn ti wọn pe ara wọn ni eniyan Ọlọrun ti ṣe kẹgan ọrọ ikilọ.

Kilo wa de ti awọn ijọ ko fi tẹwọgba ikọni ati iwaasu ipadabọ Kristi lẹẹkeji? Nigba ti o jẹ wipe wiwa Oluwa mu ègbé ati iparun ba awọn eniyan buburu, ti o si kun fun ayọ ati ireti fun awọn olododo. Otitọ nla yii ni o ti n jẹ itunu awọn olootọ Ọlọrun lati igba yii wa; kilo wa de, gẹgẹ bi Olupilẹṣẹ rẹ, ti o fi di "okuta idigbolu" ati "apata ikọsẹ" si awọn eniyan Rẹ? Oluwa wa funra Rẹ ni o ṣeleri fun awọn ọmọ ẹyin Rẹ pe: "Bi mo ba lọ lati pese aye silẹ fun yin, Emi yoo pada wa lati gba yin si ọdọ Emi tikalara Mi." Johanu 14:3. Olugbala alaanu, ti o wo idanikanwa ati ibanujẹ awọn atẹle Rẹ, ni o sọ fun awọn angẹli lati tu wọn ninu pẹlu idaniloju wipe Oun yoo pada wa ni eniyan, ani gẹgẹ bi O ti lọ si ọrun. Bi awọn ọmọ ẹyin ti n tẹju mọ oke ọrun, lati ṣe awokẹyin Ẹni ti wọn fẹran, awọn ọrọ wọnyi ni wọn gbọ: "Ẹyin ara Galili, eeṣe ti ẹyin fi n duro wo oju ọrun? Jesu yii kan naa ti a gba kuro lọwọ yin lọ si ọrun, yoo pada wa bẹẹ gẹgẹ bi ẹyin ti ri ti O lọ si ọrun." Iṣe 1:11. Iṣẹ iranṣẹ awọn angẹli tun sọ ireti wọn ji. Awọn ọmọ ẹyin "pada si Jerusalẹmu pẹlu ayọ nla: wọn si n wa ninu tẹmpili nigba gbogbo, wọn n yin, wọn si n bukun Ọlọrun." Luku 24:52, 53. Inu wọn ko dun nitori pe Jesu kuro ni ọdọ wọn, ti a si fi wọn silẹ lati jijakadi pẹlu wahala ati idanwo aye, ṣugbọn nitori idaniloju awọn angẹli naa wipe, yoo pada wa.

Ni akoko yii, ikede nipa wiwa Kristi yẹ ki o dabi eyi ti awọn angẹli ṣe fun awọn darandaran ti Bẹtlẹhẹmu, iroyin rere ti ayọ nla. Awọn ti wọn fẹran Olugbala nitootọ ko le ṣe ayafi ki wọn fi ayọ kede iroyin ti o da lori ọrọ Ọlọrun wipe Ẹni ti ireti wọn fun iye ainipẹkun dale lori n padabọ, kii ṣe lati kẹgan Rẹ, tabi lati kọ Ọ silẹ, tabi lati fi ṣe ẹlẹya, gẹgẹ bi o ti ṣẹlẹ ni igba wiwa Rẹ lakọkọ, ṣugbọn pẹlu agbara ati ogo lati ra awọn eniyan Rẹ pada. Awọn ti ko fẹran Olugbala ni wọn fẹ ki O duro

sọhun, a ko tun le ri ẹri ti o daju miran wipe awọn ijọ ti yapa kuro lọdọ Ọlọrun ju ibinu ati ikorira ti iṣẹ iranṣẹ lati Ọrun wa yii mu wa lọ.

Awọn ti wọn gba ikọni ti ipadabọ ji dide si ironupiwada ati irẹra-ẹni-silẹ niwaju Ọlọrun. Ọpọlọpọ ni wọn duro laarin Kristi ati aye; bayii wọn ri wipe o to akoko lati pinu. "Ohun iye ainipẹkun wa jẹ otitọ fun wọn. Ọrun sunmọ wọn, wọn si ri wipe wọn jẹbi niwaju Ọlọrun." A sọ awọn Kristẹni ji si igbesi aye ẹmi tuntun. A jẹ ki wọn mọ wipe akoko kúrú, wipe wọn nilati ṣe ohunkohun ti wọn ba fẹ ṣe fun eniyan ni kiakia. Aye fasẹyin, o dabi ẹnipe a ṣi iye ainipẹkun silẹ niwaju wọn, ati ọkan wọn, pẹlu ohun gbogbo ti o ni i ṣe pẹlu irọrun tabi wahala aye rẹ, dabi enipe ó kẹyin si ohun gbogbo ti o nii ṣe pelu aye yii. Ẹmi Ọlọrun ba le wọn O si fi agbara fun ipẹ atọkanwa wọn fun awọn arakunrin wọn, ati fun awọn ẹlẹṣẹ lati mura silẹ fun ọjọ Ọlọrun. Ẹri igbe aye ojoojumọ wọn ti ko fa ariwo jẹ ibawi atigbadegba fun awọn ọmọ ijọ lasan ati awọn ti ko ni ẹmi ifaraẹnijin. Awọn wọnyi ko fẹ ki a damu wọn ni bi wọn ti n le faaji, bi wọn ti n fẹ lati ni owo ati ifẹ wọn fun ọla aye. Eyi ni o fa ikorira ati atako fun igbagbọ nipa ipadabọ ati si awọn ti n kede rẹ.

Bi koko ọrọ ninu awọn akoko isọtẹlẹ ko ti ṣe e bi ṣubu, awọn alatako rẹ ṣa ipa lati maṣe jẹ ki awọn eniyan o ṣe ayẹwo rẹ nipa kikọ ni wipe a ti sé awọn asọtẹlẹ pa. Bayii ni awọn Protestant ṣe rin ni ilana awọn ẹlẹsin Romu. Nigba ti ijọ padi gbe Bibeli pamọ kuro lọdọ awọn eniyan, awọn ijọ Protestant sọ wipe eyi ti o ṣe pataki ninu ọrọ Ọlọrun—abala eyi ti o sọ nipa awọn otitọ ti wọn ni i ṣe pẹlu akoko wa—kò le yeni.

Awọn alufa ati awọn eniyan kede wipe awọn asọtẹlẹ Danieli ati ti Ifihan jẹ awọn ohun ijinlẹ ti ko le yeni. Ṣugbọn Kristi dari awọn ọmọ ẹyin Rẹ si ọrọ woli Danieli nipa awọn iṣẹlẹ ti yoo ṣẹlẹ ni akoko wọn, O sọ pe: "Jẹ ki ẹnikẹni ti o ba ka a ki o ni oye." Matiu 24:15. Ọrọ wipe iwe Ifihan jẹ ohun ijinlẹ ti ko le yeni, tako akọle iwe naa funra rẹ: "Ifihan Jesu Kristi, ti Ọlọrun fi fun, lati fihan awọn iranṣẹ Rẹ, awọn ohun ti yoo ṣẹlẹ laipẹ. . . . Ibukun ni fun ẹni ti o ka a, ati awọn ti wọn gbọ, ọrọ asọtẹlẹ yii, ti wọn si pa awọn ohun ti a kọ sinu rẹ mọ: nitori ti akoko sunmọ etile." Ifihan 1:1-3.

Woli naa sọ wipe: "Ibukun ni fun ẹni ti o ka a"—awọn kan wa ti ko ni ka a; ibukun naa ki i ṣe fun wọn. "Ati awọn ti wọn gbọ"—awọn kan wa pẹlu ti wọn kọ lati gbọ ohunkohun nipa awọn asọtẹlẹ; ibukun naa ki i ṣe fun awọn ẹgbẹ yii. "Ti wọn si pa ohun ti a kọ sinu rẹ mọ"—ọpọ ni wọn kọ lati tẹti si ikilọ ati iyanju ti o wa ninu Ifihan; ko si ọkan ninu awọn wọnyi ti o le gba ibukun ti a ṣeleri. Gbogbo awọn ti wọn fi ọrọ asọtẹlẹ ṣe ẹlẹya, ti wọn fi awọn ami inu rẹ ṣe ẹsin, gbogbo awọn ti

wọn kọ lati tun aye wọn ṣe ati lati mura silẹ de wiwa Ọmọ eniyan ko ni jẹ alabukunfun.

Pẹlu ẹri Imisi niwaju wa, bawo ni eniyan ṣe le koni wipe iwe Ifihan jẹ ohun ijinlẹ ti o kọja oye eniyan? O jẹ ohun ijinlẹ ti a fihan, iwe ti a ṣi silẹ. Kikọ nipa iwe Ifihan dari oye eniyan si awọn asọtẹlẹ Danieli, ti awọn mejeeji si ṣe afihan ikọni ti o ṣe pataki julọ, ti Ọlọrun fun eniyan, nipa awọn iṣẹlẹ ti yoo ṣẹlẹ ni opin itan aye yii.

A ṣi awọn iṣẹlẹ ti wọn jinlẹ ti wọn si ṣe pataki ninu iriri ijọ han Johanu. O ri ipo ewu, ijakadi ati idande nikẹyin fun awọn eniyan Ọlọrun. O ṣe akọsilẹ awọn iṣẹ iranṣẹ ti wọn kẹyin ti yoo mu ki ikore aye yii pọn, boya gẹgẹ bi iti fun àká ọrun ni o tabi gẹgẹ bi ohun idana fun ina apanirun. Awọn koko ọrọ ti wọn ṣe pataki jọjọ ni a fi han an, ni pataki julọ fun ijọ ti o kẹyin, pe ki awọn ti wọn ba fẹ yi kuro ninu irọ wa si otitọ le mọ nipa awọn ewu ati ijakadi ti o wa niwaju wọn. Ko si ẹni ti o yẹ ki o wa ninu okunkun nipa ohun ti n bọwa si ori ilẹ aye.

Ki lo de ti aimọkan fi wọpọ nipa abala Iwe Mimọ ti o ṣe pataki yii? Ki lo de ti awọn eniyan fi n lọra lati ṣe ayẹwo awọn ikọni rẹ? Nitori akitiyan ọmọ alade okunkun ni lati maṣe jẹ ki awọn eniyan o ri ohun ti o n ṣe afihan ẹtan rẹ. Nitori idi eyi, Kristi Onifihan, ti O ri ogun ti a o ṣi si kikẹkọ iwe Ifihan, kede ibukun si ori gbogbo awọn ti wọn yoo ka, gbọ ati ṣe awọn ọrọ asọtẹlẹ.

19

Imọlẹ Laarin Okunkun

Iṣẹ Ọlọrun ninu aye lati igba de igba ṣe afihan, ijọra ti o yanilẹnu ninu gbogbo iṣẹ Atunṣe nla tabi ẹgbẹ ẹsin. Awọn ipilẹ ti Ọlọrun fi n ba awọn eniyan lò ko yatọ. Awọn ẹgbẹ pataki ti asiko yii wa ni ibamu pẹlu awọn ti atẹyin wa, iriri ijọ latẹyin wa si ni ẹkọ ti o ṣeyebiye fun akoko wa yii.

Ko si otitọ ti a kọ kedere ninu Bibeli ju eyi pe Ọlọrun nipasẹ Ẹmi Mimọ Rẹ ni pataki julọ dari awọn iranṣẹ Rẹ ni aye ninu ẹgbẹ nla fun titẹsiwaju iṣẹ igbala. Awọn eniyan jẹ irin iṣẹ ni ọwọ Ọlọrun, eyi ti O n lo lati mu erongba oore ọfẹ ati aanu Rẹ ṣẹ. Olukuluku ni o ni ipa tirẹ lati ko; olukuluku ni a fun ni iwọn imọlẹ, ti o wulo fun akoko tirẹ ti o si to lati ran an lọwọ lati ṣe iṣẹ ti Ọlọrun fun lati ṣe. Ṣugbọn ko si eniyan, bi o ti wu ki Ọrun o bu ọla fun to, ti o ni oye kikun nipa eto irapada nla tabi ti o mọyi ni kikun, erongba Ọlọrun ninu iṣẹ ti akoko rẹ. Awọn eniyan ko ni oye kikun nipa ohun ti Ọlọrun fẹ ṣe nipasẹ iṣẹ ti O fun wọn lati ṣe; wọn ko ni oye iṣẹ iranṣẹ ti wọn n kede ni orukọ Rẹ, ni gbogbo ọna ti o pin si.

"Njẹ ẹ le wa Ọlọrun rí bi? Njẹ ẹ le ri Alagbara tan patapata bi?" "Ero Mi ki i ṣe ero yin, bẹẹ ni ọna Mi ki i ṣe ọna yin ni Oluwa wi. Nitori bi ọrun ti ga ju aye lọ, bẹẹ ni ọna Mi ga ju ti yin lọ ati ero Mi ga ju ero yin." "Emi ni Ọlọrun ko si ẹlomiran bi Emi, ti o n sọ opin lati ibẹrẹ, ati lati igba atijọ awọn ohun ti koi ti i ṣẹlẹ." Jobu 11:7; Aisaya 55:8, 9; 46:9, 10.

Ani awọn woli ti wọn ri oju rere ilalọyẹ pataki ti Ẹmi ko ni oye kikun nipa awọn ifihan ti a fifun wọn. Lati akoko kan de omiran ni a n ṣipaya itumọ rẹ, bi awọn eniyan Ọlọrun ba ti ṣe nilo awọn ilana ti o wa nibẹ.

Peteru, nigba ti o n kọ nipa igbala ti a fihan nipasẹ iyinrere sọ pe: Ni ti igbala yii “awọn woli ti beere, wọn si ti fi pẹlẹkutu wa a, ti wọn sọtẹlẹ nipa oore ọfẹ ti yoo wa si ọdọ yin; ti wọn n wa kini tabi iru igba akoko wo ni Ẹmi Kristi ti o wa ninu wọn sọ, nigba ti o sọtẹlẹ nipa ijiya Kristi ati ogo ti yoo tẹle. Awọn ti a fihan fun, ki i ṣe fun awọn, tikarawọn, ṣugbọn awa ni wọn ṣiṣẹ fun.” 1 Peteru 11:10—12.

Sibẹ, bi o ti lẹ jẹ wipe a ko gba awọn woli laaye lati ni oye kikun nipa ohun ti a fihan fun wọn, wọn n fi tọkantọkan wa lati ri gbogbo imọlẹ ti Ọlọrun fẹ lati fihan. Wọn “beere, wọn tun fi pẹlẹkutu wa,” “wọn n wa kini tabi iru igba wo ni Ẹmi Kristi ti o wa ninu wọn tọka si.” Iru ẹkọ wo ni eleyi jẹ fun awọn eniyan Ọlọrun ni akoko Kristẹni, awọn ti a titori wọn fun awọn iranṣẹ Rẹ ni asọtẹlẹ wọnyi! “Awọn ni a ṣe afihan rẹ fun, ki i ṣe fun ara wọn, bikoṣe awa ni wọn jiṣẹ fun.” Ṣe ayẹwo awọn eniyan mimọ Ọlọrun wọnyẹn bi wọn “ti n beere, ti wọn si n fi pẹlẹkutu ṣe ayẹwo” nipa awọn ifihan ti a fifun wọn fun awọn ti a koi ti i bi. Fi itara mimọ wọn we aibikita eyi ti awọn ti o kẹyin, ti a fi oju rere han fun fi wo ẹbun Ọrun. Iru ibawi wo ni eyi jẹ fun aibikita ti ifẹ aye ati ifẹ irọrun fi jẹ ki eniyan o sọ pe awọn asọtẹlẹ ko le yeni!

Bi o tilẹ jẹ wipe oye kekere eniyan kò kún oju oṣuwọn lati wọ inu imọran Ẹni Ailopin, tabi ni oye kikun nipa iṣiṣẹjade erongba Rẹ, sibẹ, o saba maa n waye wipe nitori aṣiṣe tabi aikasi lati ọdọ wọn ni wọn ko fi ni oye to nipasẹ iṣẹ iranṣẹ Ọrun. Ki i ṣe igba diẹ ni iye awọn eniyan, ani ti awọn iranṣẹ Ọlọrun maa n di nitori ero eniyan, awọn aṣa ati ẹkọ eke eniyan, ti o fi jẹ wipe iwọnba perete ni wọn le ni oye rẹ mọ ninu awọn ohun nla ti O fihan ninu ọrọ Rẹ. Bakan naa ni o ṣe ṣẹlẹ pẹlu awọn ọmọ ẹyin Kristi, ani nigba ti Olugbala wa pẹlu wọn ninu ara. Iyè wọn kun fun ero ti o wọpọ nipa Mesaya gẹgẹ bi ọba aye, ti yoo gbe Israeli ga de itẹ ijọba gbogbo aye to bẹẹ gẹẹ, ti wọn ko fi le ni oye itumọ ọrọ Rẹ ti o sọtẹlẹ nipa ijiya ati iku Rẹ.

Kristi funra Rẹ ti ran wọn jade pẹlu iṣẹ iranṣẹ: “Akoko naa de, ijọba Ọlọrun ku si dẹdẹ: ẹ ronupiwada, ki ẹ si gba iyinrere gbọ.” Maku 1:15. Iṣẹ iranṣẹ yii da lori asọtẹlẹ Danieli ori kẹsan. Ọsẹ mọkandinlaadọrin (69) ti angẹli naa kede wipe yoo lọ de “Mesaya Ọmọ Alade,” pẹlu ireti giga ati iwọna pẹlu ayọ, awọn ọmọ ẹyin n fi oju ṣọna lati ri idasilẹ ijọba Mesaya ni Jerusalẹmu lati ṣe ijọba lori gbogbo aye.

Wọn waasu iṣẹ iranṣe ti Kristi fifun wọn, bi o tilẹ jẹ wipe wọn ṣi i tumọ. Lootọ ni ikede wọn da lori Danieli 9:25, wọn ko ri, ni ẹsẹ ti o tẹle ni ori kan naa wipe a o ge Mesaya naa kuro. Lati igba ti a ti bi wọn, a ti gbe ọkan lori ireti ogo ijọba aye, ti eyi si jẹ ki oju oye wọn o fọ si alaye asọtẹlẹ ati si awọn ọrọ Jesu pẹlu.

Wọn ṣe ojuṣe wọn nipa fifun orilẹ ede Ju ni ipe aanu, amọ, ni asiko gan ti wọn reti ki Oluwa wọn O gun ori itẹ Dafidi, wọn ri bi a ti mu bi ọdaran, a nà Á, a fi ṣẹsin, a da lẹbi, a si gbe kọ ori igi agbelebu Kalfari. Iru ibanujẹ ati iporuuru ọkan wo ni o wa lọkan awọn ọmọ ẹyin yẹn ni awọn ọjọ ti Oluwa wọn sun sinu iboji!

Kristi wa ni akoko gan ati ni ọna ti asọtẹlẹ gba sọ ọ. Ẹri Iwe Mimọ wa si imuṣẹ ni ręgi nipa iṣẹ iranṣẹ Rẹ. O waasu iṣẹ iranṣẹ igbala, ti "ọrọ Rẹ si wa pẹlu agbara." Ọkan awọn olugbọ Rẹ jẹri si wipe lati Ọrun ni O ti wa. Ọrọ ati Ẹmi Ọlọrun jẹri si ẹri ọrun nipa Ọmọ Rẹ.

Awọn ọmọ ẹyin si ni ifẹ ti ko le ku si Ọga wọn ti wọn fẹran. Sibẹ iyè wọn kun fun aidaniloju ati iyemeji. Ninu irora ọkan wọn, wọn ko ranti awọn ọrọ Kristi nigba naa, ti O tọka si ijiya ati iku Rẹ. Bi Jesu ti Nasarẹti ba ni Mesaya nitootọ, ṣe wọn a wà ninu ibanujẹ ati ijakulẹ bayii? Ibeere ti o damu ọkan wọn niyii nigba ti Olugbala wọn dubulẹ ninu iboji Rẹ ni akoko Ọjọ Isinmi ainireti yẹn ti o wa laarin iku ati ajinde Rẹ.

Bi o tilẹ jẹ wipe aṣalẹ ibanujẹ ko ara jọ pọ mọ awọn atẹle Kristi; sibẹ a ko fi wọn silẹ. Woli naa wi pe: "Nigba ti mo ba joko sinu okunkun, Oluwa yoo jẹ imọlẹ si mi. . . . Yoo mu mi wa sinu imọlẹ, emi yoo si ri ododo Rẹ." "Bẹẹ ni, okunkun ko muni pamọ kuro lọdọ Rẹ; ṣugbọn aṣalẹ n tan bi ọsan ni: bakan naa ni okunkun ati imọlẹ ri ni oju Rẹ." Ọlọrun sọrọ: "Imọlẹ dide si olododo ninu okunkun." "Emi yoo mu afọju rin ni ọna ti wọn ko mọ; Emi yoo mu wọn rin ni oju ọna ti wọn koi tii mọ: Emi yoo sọ okunkun di imọlẹ niwaju wọn, ati ohun kọlọkọlọ yoo di nínà. Awọn nnkan wọnyi ni Emi yoo ṣe fun wọn, Emi ki yoo si kọ wọn silẹ." Mika 7:8, 9; O. Dafidi 139:12; 112:4; Aisaya 42:16.

Ikede ti awọn ọmọ ẹyin ṣe ni orukọ Oluwa tọna ninu ohun gbogbo, awọn asọtẹlẹ ti o tọka si si n ṣẹlẹ. "Akoko naa ti di mimuṣẹ, ijọba Ọlọrun ku si dẹdẹ," ni iṣẹ iranṣẹ wọn. Nigba ti "akoko naa" pari, 69 ọsẹ ti Danieli 9, eyi ti o lọ de ọdọ Mesaya, "Ẹni Ami Ororo"—Kristi ti gba ami ororo Ẹmi Mimọ lẹyin ti Johanu tẹ Ẹ bọmi ni Jọdani. "Ijọba Ọlọrun," eyi ti wọn kede wipe o ku si dẹdẹ, ni iku Kristi da silẹ. Ijọba yii kii ṣe, gẹgẹ bi a ti kọ wọn lati gbagbọ, ijọba aye. Bẹẹ ni ki i ṣe ijọba ọjọ iwaju, ijọba ainipẹkun eyi ti a o gbe kalẹ nigba ti "ijọba ati agbara, ati titobi ijọba labẹ ọrun yoo jẹ ti awọn eniyan mimọ Ọga Ogo;" ijọba ainipẹkun naa, ninu eyi ti "gbogbo agbara aye yoo sin In, wọn yoo si gbọ tirẹ." Danięli 7:27. Gẹgẹ bi a ti lo o ninu Bibeli, ọrọ ti a pe ni "ijọba Ọlọrun" ni a lo lati tumọ si ijọba oore ọfẹ ati ijọba ogo. Ijọba oore ọfẹ ni Pọlu ṣe alaye rẹ ninu Episteli si awọn ara Heberu. Lẹyin ti o tọka si Kristi, alagbawi alaanu, Ẹni ti o "ni imọlara ẹmi ailera wa," apostoli naa sọ wipe: "Nitori naa, ẹ jẹ ki a fi agbara wá siwaju itẹ oore ọfẹ, ki

a baa le ri aanu gba, ki a si ri oore ọfẹ." Heberu 4:15, 16. Itẹ oore ọfẹ tumọ si ijọba oore ọfẹ; nitori ti a sọ nipa itẹ, eyi tumọ si wipe ijọba wa nibẹ pẹlu. Ninu ọpọlọpọ owe Rẹ Kristi lo ọrọ "ijọba ọrun" lati ṣe alaye iṣẹ oore ọfẹ ọrun lori ọkan awọn eniyan.

Nitori naa itẹ ogo tumọ si ijọba ogo; ijọba yii ni a sọ nipa rẹ ninu ọrọ Olugbala: "Nigba ti Ọmọ eniyan yoo wá ninu ogo Rẹ, ati gbogbo awọn angẹli mimọ pẹlu Rẹ, nigba naa ni yoo joko lori itẹ ogo Rẹ: gbogbo awọn orilẹ ede yoo si pejọ niwaju Rẹ." Matiu 25:31, 32. Ijọba yii si wa ni ọjọ iwaju. A ko ni gbe e kalẹ titi fi di akoko ipadabọ Kristi lẹẹkeji.

A gbe ijoba oore ọfẹ kalẹ lọgan lẹyin ti eniyan ṣubu, nigba ti a ṣe eto fun irapada iran ti o jẹbi. O wà nigba naa ninu eto ati nipasẹ ileri Ọlọrun; nipa igbagbọ, awọn eniyan le di ọmọ ijọba naa. Sibẹ, a ko daa silẹ ni pato titi fi di akoko iku Kristi. Ani nigba ti o bẹrẹ iṣẹ Rẹ, Olugbala le yi pada kuro ninu ẹbọ ti Kalfari nigba ti orikunkun ati aimoore eniyan da A lagara. Ni Gestemane ago iparun mì ni ọwọ Rẹ. O le nu oogun ẹjẹ oju Rẹ kuro ki O si jẹ ki iran ti o jẹbi ṣegbe ninu aiṣedeede wọn. Bi o ba ṣe eyi, ko ni si irapada fun eniyan ti o ṣubu. Ṣugbọn nigba ti Olugbala fi ẹmi Rẹ lelẹ, pẹlu eemi ikẹyin Rẹ ti O kigbe, "O pari," nigba naa ni a fi idi eto irapada lelẹ. A fi ontẹ lu ileri igbala ti a ṣe fun tọkọtiyawo ẹlẹṣẹ ni Edẹni. Nigba naa ni a wa gbe ijọba alaafia, eyi ti o wa tẹle nipasẹ ileri Ọlọrun kalẹ.

Nitori naa iku Kristi—iṣẹlẹ gan eyi ti awọn ọmọ ẹyin wo gẹgẹ bi iparun ti o kẹyin fun ireti wọn—ni eyi ti o fi idi rẹ mulẹ titi aye. Bi o tilẹ jẹ wipe o mu ijakulẹ kikoro ba wọn, o je ẹri ti o ga julọ wipe igbagbọ wọn tọna. Iṣẹlẹ naa ti o mu ki wọn kun fun ọfọ ati iporuuru ọkan ni eyi ti o ṣi ilẹkun ireti fun gbogbo awọn ọmọ Adamu, ati lori eyi ti aye ti n bọ ati idunu ayeraye fun gbogbo awọn olootọ Ọlọrun latẹyin wa duro le.

Awọn erongba aanu ainipẹkun n wa si imuṣẹ wọn, ani ninu ijakulẹ awọn ọmọ ẹyin. Nigba ti oore ọfẹ ọrun ati agbara ikọni Rẹ, "Ẹni ti o sọrọ bi ẹnikẹni koṣe ti i sọrọ ri" jere ọkan wọn, sibẹ wọn da idọti igberaga aye ati ọkanjuwa imọ-ti-ara-ẹni-nikan po mọ ifẹ didan ti wọn ni fun Jesu. Ani ninu yara ti wọn ti ṣe ajọ irekọja, ni akoko ọlọwọ naa nigba ti Ọga wọn ti n wọ inu ojiji Getsemani, "ija wa laarin wọn, lori ẹni ti o tobi ju." Luku 22:24. Iran wọn kún fun itẹ, ade ati ogo, nigba ti o jẹ wipe niwaju wọn ni itiju ati irora ọgba, gbọngan idajọ, ati agbelebu Kalfari wa. Igberaga ọkan wọn, ongbẹ wọn fun ogo aye ni o jẹ ki wọn di mọ ẹkọ eke akoko wọn laiwẹyin, lati maṣe kiyesi awọn ọrọ Olugbala, ti o fi han wọn bi ijọba Rẹ ti ri gan an, ti o tun tọka si irora ati iku Rẹ. A si gba awọn aṣiṣe wọnyi laaye lati dan wọn wo—o

ninilara, ṣugbọn wọn nilo rẹ—fun atunṣe wọn. Bi o tilẹ jẹ wipe awọn ọmọ ẹyin ṣe aṣiṣe nipa itumọ iṣẹ iranṣẹ wọn, ti ireti wọn ko si wa si imuṣẹ, sibẹ wọn waasu ikilọ ti Ọlọrun fifun wọn, Oluwa yoo si fi èrè fun igbagbọ wọn, yoo si bu ọla fun igbọran wọn. Awọn ni a fun ni iṣẹ ikede iyinrere ologo nipa ajinde Oluwa wọn fun gbogbo orilẹ ede. Lati pese wọn silẹ fun iṣẹ yii ni a fi gba iṣẹlẹ ti o dabi ẹnipe ó korò laaye.

Lẹyin ajinde Rẹ, Jesu fi ara han awọn ọmọ ẹyin Rẹ ni oju ọna lọ si Emausi, “bẹrẹ lati Mose ati gbogbo awọn woli, O ṣe alaye ohun gbogbo ti a sọ nipa Rẹ ninu Iwe Mimọ fun wọn.” Luku 24:27. Ọkan awọn ọmọ ẹyin ru soke. Igbagbọ soji. A “tun wọn bi sinu ireti ti o wa laaye” ani ki Jesu to fi ara Rẹ han fun wọn. Erongba Rẹ ni lati tan imọlẹ si iye wọn ki O si so igbagbọ wọn mọ “ọrọ asọtẹlẹ ti o daju.” O fẹ ki otitọ o fi ẹsẹ mulẹ ninu ọkan wọn, ki i ṣe nitori pe Oun ni o sọ ọ lasan, ṣugbọn nitori ẹri ti a ko le ṣeyemeji rẹ, ti apẹẹrẹ ati ojiji ofin ati awọn asọtẹlẹ Majẹmu Laelae gbé kalẹ. O ṣe pataki ki awọn atẹle Kristi ni igbagbọ ti o duro lori oye, ki i ṣe nitori ara wọn nikan, ṣugbọn nitori ki wọn baa le fun araye ni imọ Kristi. Gẹgẹ bi ọna akọkọ ninu kikọni ni imọ yii, Jesu dari awọn ọmọ ẹyin Rẹ lọ si “Mose ati gbogbo woli.” Eyi ni ẹri ti Olugbala ti ó jinde fifunni nipa bi Iwe Majẹmu Laelae ti ṣe pataki ati bi o ti niye lori to.

Iru iyipada wo ni o ṣẹlẹ ninu ọkan awọn ọmọ ẹyin Rẹ bi wọn ti n wo oju Oluwa wọn ti wọn fẹran! Luku 24: 32. Ni ọna ti o peyeju ti tẹlẹ lọ, wọn “ri I, Ẹni ti Mose ninu ofin, ati awọn woli kọ nipa.” Idaniloju ti o peye ati igbagbọ ti o mọlẹ kedere rọpo ainidaniloju ati iporuuru ọkan. Idi abajọ ti wọn fi “wà ninu tẹmpili nigba gbogbo, ti wọn n yin, ti wọn si n bukun Ọlọrun” lẹyin ti a gba A soke tan. Awọn eniyan, ti o jẹ wipe iku atiniloju Olugbala wọn nikan ni wọn mọ, n wọna lati ri ibanujẹ, iporuuru ati ibaku loju wọn; ṣugbọn wọn ri idunnu ati iṣẹgun. Iru igbaradi wo ni awọn ọmọ ẹyin ri gba fun iṣẹ ti o wa niwaju wọn! Wọn ti la idanwo giga kọja, wọn si ri bi ọrọ Ọlọrun ti di mimuṣe ni ọna iṣẹgun, nigba ti o dabi ẹnipe ohun gbogbo baku ni oju eniyan. Lati akoko yii lọ, kini o le doju kọ igbagbọ wọn, tabi ti o le ko irẹwẹsi ba ifẹ wọn? Ninu ibanujẹ ti o pọ jọjọ, wọn ni “itunu ti o lagbara,” ireti ti o jẹ “idakọro fun ọkan, ti o ṣe e fi ọkan tan, ti o duro gbọin.” Heberu 6:18, 19. Wọn ti jẹ ẹlẹri si ọgbọn ati agbara Ọlọrun, o si ti “da wọn loju wipe, ki i ṣe iku, tabi iye, tabi awọn angẹli, tabi awọn ijoye, tabi awọn agbara, tabi ohun ti asiko yii, tabi awọn ohun ti n bọ, tabi oke, tabi ọgbun, tabi ẹda miran,” ni yoo le ya wọn nipa kuro ninu “ifẹ Ọlọrun, eyi ti o wa ninu Kristi Jesu Oluwa wa.” Wọn sọ pe, “Ninu gbogbo nnkan wọnyii, a ju aṣẹgun lọ nipasẹ Ẹni ti o fẹ wa.” Romu

8:38, 39, 37. “Ọrọ Ọlọrun duro titi lae.” 1 Peteru 1:25. Ati “tani ẹni ti n danilẹbi? Kristi ti O ku ni, bẹẹ ni, ti O jinde pẹlu, ti O wa ni ọwọ ọtun Ọlọrun ti O tun n bẹbẹ fun wa.” Romu 8:34.

Oluwa wipe: “Oju ki yoo ti awọn eniyan Mi.” Joẹli 2:26. “Ẹkun le pẹ di alẹ kan, ṣugbọn ayọ n bọ ni owurọ.” O. Dafidi 30:5. Nigba ti awọn ọmọ ẹyin wọnyi pade Olugbala wọn ni ọjọ ajinde, ti ọkan wọn n gbina ninu wọn bi wọn ti n tẹti si ọrọ Rẹ; nigba ti wọn ri ori ati ọwọ ati ẹsẹ ti a ṣa lọgbẹ fun wọn; nigba ti, ṣaaju igbasoke Rẹ, Jesu dari wọn lọ si Bẹtani, ti O gbe ọwọ Rẹ soke ni ibukun, ti O wipe, “Ẹ lọ sinu aye gbogbo, ki ẹ si waasu iyinrere,” O fikun wipe, “Kiyesii, Emi wa pẹlu yin titi lae” (Maku 16:15; Matiu 28:20); ni ọjọ Pẹntikọsti nigba ti Olutunu ti a ṣeleri sọkalẹ, ti a funni ni agbara lati oke wa, ti ọkan awọn onigbagbọ yọ pẹlu imọlara wipe Oluwa wọn ti a gba soke wà pẹlu wọn—nigba naa, bi o tilẹ jẹ wipe, gẹgẹ bii ti Rẹ, oju ọna wọn gba ifirubọ ati ijẹriku kọja, ṣe wọn a ṣe paṣiparọ iṣẹ iranṣẹ iyinrere oore ọfẹ Rẹ pẹlu “ade ododo” ti wọn yoo gba ni igba wiwa Rẹ, fun ogo itẹ aye, eyi ti o jẹ ireti wọn ni akọkọ iṣẹ ọmọ ẹyin wọn ni igba iṣaaju? Ẹni ti O “le ṣe pupọ ju eyi ti a beere lọ tabi ti a le ronu lọ,” ti fun wọn, pẹlu idapọ ijiya Rẹ, ibaṣepọ ayọ Rẹ—ayọ “mimu ọpọlọpọ ọmọ wa sinu ogo,” ayọ ti ko ṣe e fẹnu sọ, “ogo ainipẹkun ti o wuwo” ti Pọlu sọ pe “ijiya wa kekere yii, ti o wa fun igba diẹ, “ko to lati fi ṣe akawe” rẹ.

Iriri awọn ọmọ ẹyin ti wọn waasu “iyinrere ijọba naa” ni igba wiwa Kristi lakọkọ, ní afiwe ninu iriri awọn ti wọn kede iyinrere ipadabọ Rẹ lẹẹkeji. Bi awọn ọmọ ẹyin ti jade ti wọn n kede, “Akoko naa de, ijọba Ọlọrun ku si dẹdẹ,” bẹẹ gẹgẹ ni Miller ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ kede akoko ti o gun julọ, ti o tun kẹyin ninu akoko isọtẹlẹ ti Bibeli sọ wipe o fẹ pari, wipe idajọ ku si dẹdẹ, ati pe ijọba ainipẹkun ti fẹ wọle. Iwaasu awọn ọmọ ẹyin nipa akoko duro lori aadọrin ọsẹ ti inu Danieli 9. Iṣẹ iranṣẹ ti Miller ati awọn akẹgbẹ rẹ waasu kede opin 2300 ọjọ ti Danieli 8:14, eyi ti aadọrin ọsẹ wa lara rẹ. Iwaasu ikọọkan wọn duro lori imuṣẹ abala ọtọọtọ ninu akọsilẹ nla kan naa.

Bi ti awọn ọmọ ẹyin akọkọ, William Miller ati awọn akẹgbẹ rẹ, funra wọn ko ni oye kikun nipa itumọ iṣẹ iranṣẹ ti wọn n waasu. Awọn aṣiṣe ti wọn ti fi idi mulẹ ninu ijọ ṣe idena fun wọn lati ri itumọ ti o tọna fun koko ti o ṣe pataki ninu asọtẹlẹ naa. Nitori naa, bi o tilẹ jẹ wipe wọn kede iṣẹ iranṣẹ ti Ọlọrun fifun wọn fun araye, sibẹ nipasẹ aṣiṣe ninu itumọ rẹ, wọn jiya ijakulẹ.

Ni ṣiṣe alaye Danieli 8:14, “Titi di 2300 ọjọ; nigba naa ni a o ṣe iwẹnumọ ibi mimọ,” Miller gẹgẹ bi a ti sọ ọ, gba ero ti o wọpọ wipe aye ni ibi mimọ, o si gbagbọ wipe ṣiṣe iwẹnumọ ibi mimọ tumọ si fifọ aye mọ pẹlu ina ni igba wiwa Oluwa. Nitori naa, nigba ti o ri wipe

a ṣe asọtẹlẹ opin ọjọ ni pato, o pinu wipe akoko ti a fihan yii ni yoo jẹ akoko bibọ lẹẹkeji. Aṣiṣe rẹ waye latari gbigba ero ti o wọpọ nipa ohun ti ibi mimo tumọ si.

Ninu eto ti apẹẹrẹ, eyi ti o jẹ ojiji irubọ ati iṣẹ alufa Kristi, iwẹnumọ ibi mimọ ni eto ti o kẹyin tí olu-alufa maa n ṣe ninu iṣẹ rẹ lọdọọdun. O jẹ opin iṣẹ iwẹnumọ ẹṣẹ—mimu ẹṣẹ kuro ninu Israeli. O jẹ apẹẹrẹ iṣẹ ti o kẹyin ninu iṣẹ iranṣẹ Olu Alufa wa ni ọrun, ni ṣiṣe imukuro tabi fifọ ẹṣẹ awọn eniyan Rẹ mọ, ti a kọ silẹ ninu iwe ọrun. Isin yii nilo iṣẹ iyẹwewo, ati iṣẹ idajọ; wiwa Kristi ninu ikuuku awọsanma pẹlu agbara ati ogo nla ni yoo tẹle eyi; nitori nigba ti O ba de, a yoo ti ṣe ipinu lori gbogbo ọrọ. Jesu sọ wipe: "Ere Mi n bẹ pẹlu Mi, lati fifun olukuluku gẹgẹ bi iṣẹ rẹ yoo ti ri." Ifihan 22:12. Iṣẹ idajọ yii, ti yoo ṣaaju ipadabọ lẹẹkeji, ni a kede rẹ ninu iṣẹ iranṣẹ angẹli akọkọ ti Ifihan 14:7: "Bẹru Ọlọrun, ki ẹ si fi ogo fun; nitori ti wakati idajọ Rẹ de."

Awọn ti wọn kede ikilọ yii kede iṣẹ iranṣẹ ti o yẹ ni akoko ti o yẹ. Ṣugbọn bi awọn ọmọ ẹyin akọkọ ti kede, "Akoko naa de, ijọba Ọlọrun ku si dẹdẹ," ti o duro lori asọtẹlẹ Danieli 9, nigba ti wọn baku lati ni oye wipe a ṣe asọtẹlẹ iku Mesaya ninu Iwe kan naa, bẹẹ gẹgẹ ni Miller ati awọn akẹgbẹ rẹ waasu iṣẹ iranṣẹ ti o duro lori Danieli 8:14 ati Ifihan 14:7, ṣugbọn ti wọn ko ri awọn iṣẹ iranṣẹ miran ti a tẹ jade ninu Ifihan 14, ti o yẹ ki a fifunni pẹlu ṣaaju wiwa Oluwa. Bi awọn ọmọ ẹyin ti ṣe aṣiṣe nipa iru ijọba ti a yoo gbe kalẹ ni opin aadọrin ọsẹ, bẹẹ gẹgẹ ni awọn Onireti ṣe ṣe aṣiṣe nipa iṣelẹ ti yoo ṣẹlẹ ni opin 2300 ọjọ. Ninu ọrọ mejeeji, wọn gba tabi wọn ṣe igbọran si aṣiṣe ti o wọpọ, eyi ti o fọ awọn eniyan loju si otitọ. Awọn ẹgbẹ mejeeji ni wọn ṣe ifẹ Ọlọrun nipa wiwaasu, awọn mejeeji pẹlu ní ṣiṣe aṣiṣe ninu oye iṣẹ iranṣẹ wọn, wọn ri ijakulẹ.

Sibẹ, Ọlọrun mu ero aanu Rẹ ṣẹ ni jijẹ ki ikilọ idajọ o jade bi o ti ṣe jade. Ọjọ nla naa sunmọ etile, ninu iṣọwọṣiṣẹ Rẹ, awọn eniyan ri idanwo lori akoko kan pato lati le ṣe afihan ohun ti n bẹ ninu ọkan wọn. A gbe iṣẹ iranṣẹ naa kalẹ fun idanwo ati ifọmọ ijọ. A jẹ ki wọn ri boya ifẹ wọn wa lori aye yii, tabi lori Kristi ati ọrun. Wọn sọ wipe wọn fẹran Olugbala; bayii ki wọn wa jẹri si ifẹ wọn. Ṣe wọn ṣetan lati kọ ireti ati ifẹ aye silẹ, ki wọn si ki Oluwa wọn kaabọ pẹlu ayọ? A gbe iṣẹ iranṣẹ naa kalẹ lati le jẹ ki wọn ri ipo ti wọn wa ninu ẹmi; a ran si wọn ninu aanu lati ta wọn ji lati wa Oluwa pẹlu ironupiwada ti irẹlẹ.

Ijakulẹ naa, bi o tilẹ jẹ wipe o jẹ atubọtan iṣitumọ iṣẹ iranṣẹ ti wọn fifun ni, o ṣiṣẹ fun rere. O dan ọkan awọn ti wọn sọ wipe wọn gba ikilọ naa wo. Ninu ijakulẹ wọn, ṣe wọn a fi igbonara sọ iriri wọn nù ni, ti wọn a si sọ igbẹkẹle wọn ninu ọrọ Ọlọrun nu? a bi pẹlu adura ati irẹlẹ, wọn a wa lati mọ ibi ti wọn ti baku lati mọ itumọ asọtẹlẹ naa?

Melo ninu wọn ni o jẹ wipe ibẹru ni o mu wọn lọkan, tabi ti wọn ṣiṣẹ nitori igbonara ati oofa ọkan? Melo ninu wọn ni ko fi ọkan kan ṣiṣẹ ti wọn tun jẹ alaigbagbọ? Ọpọ ero ni wọn kede wipe wọn fẹran wiwa Oluwa. Nigba ti a pe wọn lati fi ara da ẹgan ati itiju araye, ati idanwo ati ijakulẹ, ṣe wọn a kọ igbagbọ naa silẹ bi? Nitori ti bi Ọlọrun ti n ba wọn lò kò tete yé wọn, ṣe wọn a sọ otitọ, ti ẹri ti o han kedere ninu ọrọ Rẹ tilẹyin, nu bi?

Idanwo yii yoo fi okun awọn ti wọn fi igbagbọ tootọ ṣe igbọran si ohun ti wọn gbagbọ wipe o jẹ ikọni ọrọ ati Ẹmi Ọlọrun han. Yoo kọ wọn, bi iru iriri yii nikan ṣoṣo ti le kọni, ewu ti o wa ninu gbigba ero ati itumọ eniyan, dipo ki a fi Bibeli ṣe itumọ ara rẹ. Fun awọn ọmọ igbagbọ iporuuru ọkan ati ibanujẹ ti o jẹyọ latari aṣiṣe wọn yoo ṣe iṣẹ atunse ti wọn nilo. Yoo dari wọn lati kọ ẹkọ si nipa ọrọ asọtẹlẹ. Wọn yoo kọ lati fi iṣọra ṣe ayẹwo ipilẹ igbagbọ wọn, ki wọn si kọ ohun gbogbo, bi o ti wu ki gbogbo Kristeni o gba a to, ti ko si ninu Iwe Mimọ otitọ silẹ.

Pẹlu awọn onigbagbọ yii, gẹgẹ bi o ti ri pẹlu awọn ọmọlẹyin akọkọ, eyi ti o dabi ẹnipe o ṣokunkun si oye wọn ni akoko idanwo ni yoo han kedere nikẹyin. Nigba ti wọn ba ri “opin Oluwa” wọn yoo mọ wipe, pẹlu idanwo ti o jade latari aṣiṣe wọn, ero ifẹ Rẹ si wọn n wa si imuṣẹ laisi idena. Wọn yoo kọ nipasẹ iriri ibukun wipe O jẹ “oniyọnu jọjọ ati alaanu;” wipe gbogbo ọna Rẹ “jẹ aanu ati otitọ si awọn ti wọn pa majẹmu ati ẹri Rẹ mọ.”

20

Isọji Nla Ti Ẹsin

Ninu asọtẹlẹ iṣẹ iranṣẹ angẹli akọkọ ti Ifihan 14, a sọ nipa isọji nla ti ẹsin kan labẹ ipolongo wiwa Kristi laipẹ. A ri angẹli kan ti o n fo “laarin agbede meji ọrun, ti oun ti iyinrere ainipẹkun lati waasu fun awọn ti n gbe ori ilẹ aye, ati si gbogbo orilẹ ede, ati ẹya, ati ede, ati eniyan.” “Pẹlu ohùn rara”, o kede iṣẹ iranṣẹ naa wipe: “Bẹru Ọlọrun ki ẹ si fi ogo fun nitori ti wakati idajọ Rẹ de: ki ẹ si jọsin Ẹni ti o da ọrun ati aye, ati okun, ati awọn orisun omi.” Ẹsẹ 6, 7.

Nitori ti a sọ wipe angẹli ni o n kede ikilọ pataki yii ṣe pataki. Nipasẹ iwa mimọ, ogo, ati agbara iranṣẹ ọrun, o tẹ ọgbọn Ọlọrun lọrun lati ṣe afihan bi iṣẹ ti a fẹ ki iṣẹ iranṣẹ yii ṣe ti ṣe pataki tó ati agbara ati ogo ti yoo tẹle. Angẹli naa si n fo ni “agbede meji ọrun,” “ohùn rara”ni a fi kede ikilọ naa, ati kikede rẹ si gbogbo awọn “ti n gbe ori ilẹ aye,” —”si gbogbo orilẹ ede, ati ẹya, ati ede, ati eniyan”—sọ nipa bi ẹgbẹ yii yoo ti yara kankan to ati bi yoo ti tan ka gbogbo aye to.

Iṣẹ iranṣẹ naa funra rẹ tan imọlẹ si igba ti ẹgbẹ yii yoo wa. A sọ wipe o wa lara “iyinrere ainipẹkun;” o si kede ibẹrẹ idajọ. A ti waasu iṣẹ iranṣẹ igbala lati igba yii wa; ṣugbọn iṣẹ iranṣẹ yii wà lara iyinrere ti a le kede ni akoko ikẹyin nikan nitori nigba naa ni o to le jẹ wipe wakati idajọ ti de. Awọn asọtẹlẹ wọnyi ṣe afihan awọn iṣẹlẹ ti yoo pari si ibẹrẹ idajọ. Eleyi jẹ otitọ ni pataki julọ nipa iwe Danieli. Ṣugbọn abala asọtẹlẹ rẹ ti o sọ nipa ọjọ ikẹyin ni a sọ fun Danieli pe ki o tì pa, ki o si fi edidi dii “titi fi di akoko ikẹyin.” Ayafi igba ti a ba wa ninu akoko ikẹyin yii ni a to le kede iṣẹ iranṣẹ nipa idajọ, lori imuṣẹ awọn asọtẹlẹ wọnyi. Ṣugbọn woli naa sọ wipe, ni igba ikẹyin, “ọpọ ni yoo sa sihin sọhun, imọ yoo si pọ si.” Danieli 12:4.

Apostoli Pọlu kilọ fun ijọ wipe ki wọn maṣe wọna fun wiwa Kristi ni akoko tirẹ. O sọpe, “Ọjọ naa ki yoo wa ayafi bi iyapa ba kọkọ wa ná, ti a si fi ẹni ẹṣẹ nì hàn.” 2 Tẹsalonika 2:3. O di opin akoko iyapa nla naa, ati opin akoko gbọọrọ ti iṣakoso “ọkunrin ẹṣẹ” ki a to le wọna fun wiwa Oluwa wa. “Ọkunrin ẹṣẹ,” ti a tun pe ni “ohun ijinlẹ aiṣedeede,” “ọmọ ègbé,” ati “ẹni ẹṣẹ nì” duro fun ijọ padi, eyi ti, gẹgẹ bi a ti sọ ọ ninu isọtẹlẹ, yoo jọba fun 1260 ọdun. Akoko yii pari ni 1798. Wiwa Kristi ko le ṣẹlẹ ṣaaju akoko yii. Ikilọ Pọlu kari gbogbo akoko Kristẹni titi di ọdun 1798. Ni abala akoko yii ni a o kede iṣẹ iranṣẹ bibọ lẹẹkeji.

A koi tii waasu iru iṣẹ iranṣẹ yii ri. Pọlu, bi a ti ri, ko waasu rẹ; o tọka awọn arakunrin rẹ si ọjọ iwaju jijina réré gẹgẹ bi akoko wiwa Oluwa. Awọn Alatunṣe ko waasu rẹ. Martin Luther sun ọjọ idajọ si bii 300 ọdun siwaju lati akoko tirẹ. Ṣugbọn lati 1798, a ti ṣi iwe Danieli silẹ, imọ nipa isọtẹlẹ ti pọ si, ti ọpọlọpọ si ti kede iṣẹ iranṣẹ ti idajọ ti o sunmọ etile.

Gẹgẹ bi iṣẹ Atunṣe nla ti ọrundun kẹrindinlogun, ẹgbẹ ti n kede ipadabọ farahan lẹẹkan naa ní awọn orisirisi orilẹ ede ti wọn ti n ṣe ẹsin Kristẹni. Ni ilẹ Europe ati Amẹrika, a dari awọn eniyan ti wọn nigbagbọ, ti wọn si n gbadura lati kọ nipa isọtẹlẹ, nipa ṣiṣe itọlẹsẹẹsẹ akọsilẹ ti a misi, wọn ri pẹlu idaniloju wipe opin ohun gbogbo ti sunmọ etile. Ni ọpọlọpọ ilu, awọn ẹgbẹ Kristẹni ti wọn kò mọ ara wọn, ko ara wọn jọ pọ, nipasẹ ẹkọ Bibeli nikanṣoṣo, wọn ri mọ wipe wiwa Olugbala ti sunmọ etile.

Ni 1821, ọdun mẹta ṣaaju ki Miller to kọ ẹkọ isọtẹlẹ de ibi ti o tọka si akoko idajọ, Dr Joseph Wolff, “ajiyinrere si gbogbo aye,” bẹrẹ si nii polongo wipe wiwa Olugbala ti sunmọ etile. A bi Wolff si Germany, awọn obi rẹ si jẹ Heberu, baba rẹ jẹ rabbi awọn Ju. O ti gbagbọ ninu otitọ nipa ẹsin Kristẹni lati igba ti o ti wa ni ọmọde. O jẹ ọlọpọlọ pipe, ti iye rẹ yè kooro, o tẹti si ifọrọwerọ ti o waye ninu ile baba rẹ bi awọn Heberu onifọkansin ti n pejọ pọ lojoojumọ lati sọ nipa ireti ati afojusun awọn eniyan wọn, ogo Mesaya ti n bọ, ati imubọsipọ Israeli. Ni ọjọ kan, nigba ti o gbọ ti a darukọ Jesu ti Nasarẹti, ọdọmọkunrin naa beere pe tani i ṣe. “Ara Ju ti o ni ẹbun ju ẹnikẹni lọ” ni a fi da lohun; “ṣugbọn nigba ti o pe ara rẹ ni Mesaya, ajọ igbẹjọ awọn Ju da ẹjọ iku fun.” O beere pe, “Ki lo de ti a fi pa Jerusalẹmu run, ati idi ti a fi wa ni igbekun?” Baba rẹ dahun wipe, “O maṣe o! O maṣe o!, nitori ti awọn Ju pa awọn woli ni.” Ero naa wa sọ si ọkan ọmọ naa wipe: “Boya woli naa ni Jesu pẹlu, ti awọn Ju si pa a nigba ti o wa ni ailẹṣẹ.” Ifẹ ọkan rẹ lagbara debi pe, bi a tilẹ ti ṣe ofin pe ko gbọdọ wọ inu ile ijọsin, ni ọpọ igba ni a duro ni ita lati le gbọ iwaasu.

Nigba ti o jẹ ọmọ ọdun meje pere, o fọnu fun agbalagba Kristẹni kan nipa iṣẹgun ọjọ iwaju ti Israeli nigba ti Mesaya ba de, agbalagba naa fi aanu sọ fun wipe: “Ololufẹ, ọdọmọkunrin, maa sọ ẹni ti Mesaya n ṣe nitootọ fun ọ: Jesu Kristi ti Nasarẹti ni, . . . ẹni ti awọn baba nla rẹ kan mọgi; bi wọn ti ṣe si awọn woli atijọ. Lọ si ile ki o ka Aisaya ori kẹtalelaadọta, waa ri daju wipe Kristi ni Ọmọ Ọlọrun.” Igbagbọ kun inu ọkan rẹ lọgan. O lọ si ile o si ka Iwe Mimọ, o yaa lẹnu lati ri bi o ti wá si imuṣẹ rẹgi ninu Jesu ti Nasarẹti. À bí otitọ ni ọrọ awọn Kristẹni? Ọdọmọkunrin naa beere itumọ isọtẹlẹ naa lọwọ baba rẹ, ṣugbọn idakẹrọrọ kikoro ni o rí ti ko si le sọ nipa ọrọ naa mọ. Amọ eleyii tubọ jẹ ki ifẹ rẹ lati mọ nipa ẹsin Kristẹni o pọ si ni.

Imọ ti o n wa ni a mọọmọ pamọ kuro ni arọwọto rẹ ninu ile Ju rẹ; ṣugbọn nigba ti o pe ọmọ ọdun mọkanla, o kuro ni ile baba rẹ, o si wọ inu aye lọ lati wa ẹkọ funra rẹ, lati yan ẹsin ati iṣẹ ti yoo ṣe. O gbe ni ile awọn ibatan rẹ fun igba diẹ, ṣugbọn laipẹ, a le e jade bi apẹyinda, ni oun nikan, lailowolọwọ o nilati gbe igbesi aye rẹ laarin awọn ajeji. O lọ lati ibi kan si ekeji, o n fi pẹlẹkutu kẹkọ, o si n ri owo nipa kikọni ni ede Heberu. Nipasẹ olukọ Katoliki kan, o gba igbagbọ Romu o si ni ero wipe oun yoo di ajiyinrere si awọn eniyan rẹ. Pẹlu ero yii, o lọ, lẹyin ọdun diẹ, lati kẹkọ ni College of Propaganda ni Romu. Nibi, iṣesi rẹ lati da inu ro ati lati sọrọ bi nnkan ti ri mu ki o gba ẹkọ odi. O tako awọn aṣiṣe ijọ ni gbangba o tun sọ wipe wọn nilo atunṣe. Ni akọkọ awọn ijoye ijọ fi oju rere wo o, ṣugbọn lẹyin igba diẹ, a mu u kuro ni Romu. Labẹ iṣọ ijọ, o lọ lati ibi kan si ekeji, titi ti o fi han gbangba pe ko le tẹriba fun igbekun ẹsin Romu. A sọ wipe ko le ṣe e tunṣe mọ, a si fi silẹ lati lọ si ibi ti o ba fẹ. Bayii, o lọ si England, o si gba igbagbọ Protestant, o darapọ mọ ijọ England. Lẹyin ẹkọ fun ọdun meji, o jade lati bẹrẹ iṣẹ rẹ ni ọdun 1821.

Nigba ti Wolff gba otitọ nla ti wiwa Kristi ni akọkọ gẹgẹ bi “Ọkunrin Onirobinujẹ, ti o si mọ ẹdun ọkan,” o ri wipe awọn asọtẹlẹ kọni yekeyeke pẹlu nipa ipadabọ Rẹ lẹẹkeji pẹlu agbara ati ogo. Nigba ti o wọna lati dari awọn eniyan rẹ si Kristi ti Nasareti gẹgẹ bi Ẹni ti a ṣeleri, ati lati tọka wọn si wiwa Rẹ lakọkọ ni irẹlẹ gẹgẹ bi irubọ fun ẹṣẹ eniyan, o kọ wọn nipa wiwa Rẹ lẹẹkeji pẹlu gẹgẹ bi ọba ati olugbala.

O sọ pe “Jesu ti Nasarẹti, Mesaya tootọ, ẹni ti a gun ni ọwọ ati ẹṣẹ, ti a mu wa gẹgẹ bi ọdọ aguntan ti a fẹ pa, ti o jẹ Ẹni ibinujẹ ti o tun mọ ẹdun, ẹni O wa lakọkọ lẹyin ti a gba ọpa aṣẹ kuro lọwọ Juda ati agbara isofin kuro labẹ ẹsẹ rẹ; yoo wa ni ẹẹkeji ninu ikuuku awọsanma, ati pẹlu kakaki olu angẹli” “yoo si duro lori oke Olifi; ijọba naa ti a fi igba kan fifun Adamu lori gbogbo ẹda, ti o si padanu (Jẹnẹsisi 1:26; 3:17), ni a o fifun Jesu. Yoo jẹ ọba lori gbogbo aye.

Irora ati ipohunrere ẹkun ẹda yoo dopin, ṣugbọn a yoo gbọ orin iyin ati ọpẹ. . . . Nigba ti Jesu ba wá ninu ogo Baba Rẹ, pẹlu awọn angẹli mimọ, . . . awọn oku ninu Kristi ni yoo kọ jinde. I Tẹsalonika 4:16; I Kọrinti 15:32. Eyi ni awa Kristẹni pe ni ajinde akọkọ. Nigba naa ni ijọba ẹranko naa yoo yipada (Aisaya 11:6—9), wọn yoo si tẹriba fun Jesu. O. Dafidi 8. Alaafia yoo jọba ni gbogbo aye." "Lẹẹkansi Oluwa yoo boju wo aye, yoo si sọ wipe, 'Kiyesi daradara ni."

Wolff gbagbọ wipe wiwa Oluwa sunmọ etile, itumọ ti o fun awọn akoko isọtẹlẹ gbe opin ohun gbogbo si akoko ti o sunmọ akoko ti Miller tọka si pẹkipẹki. Wolff dahun si awọn ti wọn kà lati inu Iwe Mimọ wipe, "Ni ti ọjọ ati wakati ko si ẹni ti o mọ ọ," wipe eniyan ko ni mọ ohunkohun nipa bi wiwa Rẹ yoo ti sunmọ to, wipe: "Njẹ Oluwa wa sọ wipe a ko gbọdọ mọ ọjọ ati wakati bi? Ṣe ko fun wa ni awọn ami akoko, ki a le mọ bi wiwa Rẹ ba sunmọ, bi eniyan ti n mọ bi igba ẹrun ti n sunmọ nipasẹ bi igi ọpọtọ ti n yọ ewé? Matiu 24:32. Ṣe a ko gbọdọ mọ igba naa ni, nigba ti Oun funra Rẹ gba wa niyanju, kii ṣe lati ka woli Danięli nikan, ṣugbọn lati ni oye rẹ? ninu Danieli kan naa, nibi ti a ti sọ wipe ki a sé ọrọ naa mọ ọhun titi fi di akoko ikẹyin (eyi ti o ṣẹlẹ ni akoko ti Rẹ), ati wipe 'ọpọ ni yoo sa sihin sọhun' (ọrọ Heberu lati ṣalaye wíwò ati rironu lori akoko), ati pe imọ (nipa akoko naa) 'yoo pọ si' Danięli 12:4. Ni afikun, kii ṣe erongba Oluwa wa ni lati sọ pẹlu eyi wipe a ko ni mọ bi akoko ba ti n sunmọ etile, ṣugbọn wipe 'ọjọ naa ati akoko naa' ni pàtó 'ni ẹnikẹni ko mọ.' Ọpọ ninu rẹ ni O sọ wipe, a yoo mọ nipasẹ awọn ami akoko, lati le mu ki a gbaradi fun wiwa Rẹ, gẹgẹ bi Noah ti pese ọkọ silẹ."

Nipa eto itumọ, tabi aṣitumọ Bibeli ti o wọpọ, Wolff kọwe wipe: "Eyi ti o pọju ninu ijọ Kristẹni ni wọn ti yapa kuro ninu itumọ Bibeli ti o ye kooro, ti wọn si n lo ilana ironu bii ti awọn ẹlẹsin Buddha, ti wọn gbagbọ wipe idunu eniyan ni ọjọ iwaju yoo jẹ nipa rinrin ninu afẹfẹ, wọn ro wipe bi wọn ba ti ri awọn Ju wọn nilati tumọ rẹ si Keferi; nigba ti wọn ba ka Jerusalẹmu, wọn gbọdọ tumọ rẹ si ijọ; bi a ba si sọ pe aye, o tumọ si ofurufu; ati nipa wiwa Oluwa, wọn gbọdọ tumọ rẹ si itẹsiwaju awọn ẹgbẹ ajiyinrere; ati lilọ si oke Oluwa, tumọ si ipade nla ti awọn Methodist."

Laarin ọdun mẹrinlelogun, lati 1821 si 1845, Wolff ririnajo kaakiri: ni Africa, o bẹ Ijibiti ati Abyssinia wo; ni Asia, o la Palestine, Syria, Persia, Bokhana ati India kọja. O tun ṣe abẹwo si United States, ninu irin ajo rẹ sibi, o waasu ni erekuṣu Saint Helena. O lọ si New York ni August 1837; lẹyin igba ti o waasu ninu ilu naa tan, o waasu ni Philadelphia ati Baltimore, nikẹyin, o lọ si Washington. Nibi, o sọ pe "lori àbá tí ààrẹ àná, John Quincy Adams mu wá ni ọkan ninu awọn

ipade ile igbimọ aṣofin gbogbo ilẹ naa, pẹlu ohun kan, wọn gba mi laaye lati lo gbọngan ile aṣofin fun idanilẹkọ, eyi ti mo ṣe ni ọjọ Satide, ti gbogbo ọmọ ile igbimọ aṣofin si wa nibẹ, bakan naa ni bisọbu ti Virginia ati alufa ati awọn ọmọ ijọ ni Washington ṣe pẹlu. Awọn aṣejọba ni New Jersey ati Pennsylvania, ti mo ṣe idanilẹkọ lori awọn iwadi mi ni Asia, ati lori iṣejọba Kristi ní ti ara niwaju wọn, fun mi ni irú iyì kan naa."

Dr Wolff rin irinajo lọ si awọn orilẹ ede ti wọn luko julọ laisi idaabobo aṣẹ Europe kankan, o farada ọpọlọpọ ijiya, ti ewu ti a ko le ka tan si yi i ka. A na a ni atẹlẹsẹ, a fi ebi pa a, a tàá bi ẹru, ni igba mẹta ni a dajọ iku fun. Awọn olè da lọna, ni igba miran o fẹrẹ ku nitori oungbẹ. Ni ẹẹkan a gba gbogbo ohun ti o ni ni ọwọ rẹ, a si fi i silẹ lati rin ọpọ ibusọ pẹlu ẹsẹ laarin awọn oke, yinyin si n jabọ si lara, ti atẹlẹsẹ rẹ ko mọ irora mọ nitori bi o ti n fi rin lori yinyin.

Nigba ti a kilọ fun nipa lilọ si ọdọ awọn ẹya alaigbede ti ko tun koni mọra laini ohun ìjà, o sọ pe, a ti fun oun "ni awọn ohun ija"—"adura, ìtara fun Kristi, ati igboya ninu iranlọwọ Rẹ." O sọ pe, "Mo tun ni ifẹ Ọlọrun ati ti awọn alabagbe mi lọkan, Bibeli si wa ni ọwọ mi." O n gbe Bibeli ni ede Heberu ati ni ede Gẹẹsi kaakiri ibi gbogbo ti o ba n lọ. O sọ nipa ọkan ninu awọn irin ajo rẹ ti o kẹyin bayii pe: "Mo . . . ṣi Bibeli silẹ ni ọwọ mi. Mo ri wipe agbara mi wa ninu Iwe naa, ati wipe okun rẹ yoo di mi mu."

Bayii ni o ṣe ni iforiti ninu iṣẹ rẹ titi ti iṣẹ iranṣẹ idajọ ṣe de ibi pupọ ninu aye. Laarin awọn Ju, Turk, Parsee, Hindu, ati awọn ẹya ati iran miran o pin ọrọ Ọlọrun ni awọn ede wọnyii ti o si kede iṣakoso Mesaya ti n bọ.

Ninu irinajo rẹ si Bokhana o ri awọn ti wọn danikanwa ni ọna jinjin, ti wọn gbagbọ ninu ipadabọ Oluwa laipẹ. O sọ pe awọn Arab ti Yemen "ni iwe kan ti a n pe ni Seera, ti o sọ nipa ipadabọ Kristi lẹẹkeji ati iṣakoso Rẹ ninu ogo; wọn si n reti ki iṣẹlẹ nla kan o ṣẹlẹ ni ọdun 1840." "Ni Yemen . . . mo lo ọjọ mẹfa pẹlu awọn ọmọ Rekabu. Wọn kii mu ọti waini, wọn ko gbin ọgba ajara, wọn ko fun irugbin, wọn n gbe ninu agọ, wọn ranti Jonadabu, ọmọ Rekabu; mo ri awọn ọmọ Israeli ni agbo wọn, awọn ẹya Dani, . . . ti wọn n reti pẹlu awọn ọmọ Rekabu wiwa Mesaya ni kankan ninu ikuuku awọsanma."

Ajiyinrere miran tun ri wipe iru igbagbọ kan naa wa ni Tartary. Alufa ara Tartar kan beere lọwọ ajiyinrere naa nipa asiko ti Kristi yoo wa lẹẹkeji. Nigba ti ajiyinrere naa sọ wipe oun ko mọ ohun kan nipa rẹ, o ya alufa naa lẹnu jọjọ lati ri iru aimọkan bayii lọdọ ẹni ti o pe ara rẹ ni olukọ Bibeli, ti o si sọ ohun ti o gbagbọ, eyi ti o da lori asọtẹlẹ wipe Kristi n bọ laarin 1844.

Lati 1826 ni a ti n waasu iṣẹ iranṣẹ ipadabọ ni England. Ẹgbẹ naa ko ni àkóso bii ti ti ilẹ Amẹrika; kii ṣe gbogbo wọn ni wọn kọni ni akoko ti yoo wa ni pato, ṣugbọn wọn kede otitọ nla ti wiwa Kristi laipẹ ninu agbara ati ogo. Kii si i ṣe laarin awọn oniyapa ati awọn ti ko tẹle ilana Ijọ nikan. Mourant Brock, onkọwe ọmọ England kan, ṣọ wipe o to bi ẹẹdẹgbẹta (700) alufa ijọ England ti wọn n waasu "iyinrere ti ijọba yii." A waasu iṣẹ iranṣẹ ti o n tọka si 1844 gẹgẹ bi akoko bibọ Oluwa ni Great Britain pẹlu. A pin awọn iwe ti wọn ṣọ nipa ipadabọ ti wọn tẹ jade ni United States kaakiri gan an ni. A ṣe atuntẹ awọn iwe ati atẹjade keekeke wọnyi ni England. Ni 1842 Robert Winter, ẹni ti a bi ni ilẹ England, ti o gba igbagbọ nipa ipadabọ ni ilẹ Amẹrika, pada si ilu abinibi rẹ lati kede wiwa Oluwa. Ọpọ ni wọn fọwọsowọpọ pẹlu rẹ ninu iṣẹ naa, ti a si kede iṣẹ iranṣẹ idajọ kaakiri gbogbo England.

Ni South Amerika, laarin aimọkan ati arekereke awọn alufa, Lacunza ọmọ Spain, ti o jẹ Jesuit, ka Bibeli o si gba otitọ nipa ipadabọ Kristi ní kánkán. O fẹ funni ni ikilọ naa, sibẹ ko fẹ ki Romu o fiya jẹ oun, o tẹ igbagbọ rẹ jade pẹlu orukọ "Rabbi Ben-Ezra," o fi ara rẹ han bi Ju ti o yipada. Lacunza gbe ni ọrundun kejidinlogun, ṣugbọn 1825 ni iwe rẹ ti de London, a si tumọ rẹ si ede England. Atẹjade rẹ ṣiṣẹ lati mu ki ifẹ awọn eniyan England o tubọ jinlẹ si lori koko ọrọ ipadabọ lẹẹkeji.

Ni Germany, Bengel, alufa ni ijọ Lutheran ati ọjọgbọn ninu Bibeli ni o fi kọni ni ọrundun kejidinlogun. Nigba ti o pari ẹkọ rẹ, Bengel, "fi ara rẹ jin fun ẹkọ nipa ọrọ Ọlọrun, eyi tí iye rẹ ti o yè kooro ti o si já fáfá si ohun ẹsin, ati tí ikọni ati itọsọna ibẹrẹ aye rẹ dari rẹ si. Bi ti awọn ọdọmọkunrin yooku ti wọn ni arojinlẹ, ti wọn wa ṣaaju rẹ, ati nisinsinyii, o jijakadi pẹlu iyemeji ati inira nipa ẹsin, o si ṣọ pẹlu ero ọkan pupọ nipa 'ọpọ ọkọ ti o gun lọkan, ti o mu ki igba ewe rẹ o nira lati gbe.'" Nigba ti o darapọ mọ igbimọ Kadina ti ilu Wurttemberg, o ṣe alagbawi fun ominira ẹsin. "Nigba ti o daabo bo ẹtọ ati anfani ijọ, o fọwọ si ki awọn ti wọn ro wipe wọn nilati kuro ninu ijọ, nitori ẹri ọkan wọn, o ni ominira ti o yẹ." Wọn si ri anfani ẹtọ yii ni agbegbe abinibi rẹ.

Nigba ti o n kọ iwaasu kan lati inu iwe Ifihan 21 fun Sọnde ipadabọ ni imọlẹ ti ipadabọ Kristi lẹẹkeji wọ inu ọkan rẹ lọ. O ni oye asọtẹlẹ ifihan ju bi o ti ni ri lọ. Awọn iṣẹlẹ ti woli naa kọ silẹ ṣe pataki si ni ọna tuntun, awọn iṣẹlẹ ologo naa wa siwaju rẹ, o nilati dá ironu lori koko ọrọ naa duro fun igba diẹ. Ni ori pẹpẹ iwaasu iṣẹlẹ naa tun yọ si ni ọna ti o han kedere, ati pẹlu agbara. Lati igba yii lọ, o jọwọ ara rẹ fun ẹkọ isọtẹlẹ, paapa julọ, eyi ti o ṣọ nipa igba ikẹyin, laipẹ o ri wipe bibọ Kristi sunmọ etile. Ọjọ ti o yan gẹgẹ bi akoko ipadabọ lẹẹkeji fi ọdun diẹ ju eyi ti William Miller gbagbọ lọ.

Awọn iwe Bengel tan ka ibi gbogbo ti wọn ti n ṣe ẹsin Kristẹni. Wọn gba ero rẹ nipa asọtẹlẹ daradara ni Wurttemberg, a si gba a diẹ ni awọn ibi ti o ku ni Germany. Ẹgbẹ naa tẹsiwaju lẹyin iku rẹ ti a si gbọ iṣẹ iranṣẹ ipadabọ ni akoko kan naa ti wọn n fiye si ni awọn ilẹ yooku. Laipẹ, diẹ lara awọn onigbagbọ lọ si ilẹ Russia wọn si da ibudo silẹ nibẹ, awọn ijọ awọn ara Germany ni ilu naa si gbagbọ nipa ipadabọ Kristi laipẹ.

Imọlẹ naa tan ni France ati Switzerland. Ni Geneva nibi ti Farel ati Calvin ti tan otitọ iṣẹ Atunṣe kalẹ, Gausen waasu iṣẹ iranṣẹ ipadabọ lẹẹkeji. Nigba ti o jẹ akẹkọ, Gausen gba ẹmi ironu ti ko faaye gba ẹsin, eyi ti o gba gbogbo ilẹ Europe kan lati opin ọrundun kejidinlogun titi de ibẹrẹ ọrundun kọkandinlogun; nigba ti o bẹrẹ iṣẹ alufa, ki i ṣe wipe ko ni oye igbagbọ tootọ nikan, ṣugbọn o tun ṣe iyemeji nipa otitọ ọrọ Ọlọrun. Ni igba ọdọ rẹ, o nifẹ si ẹkọ isọtẹlẹ. Lẹyin ti o ka iwe Rollin, Ancient History (Itan Igba Atijọ), iye rẹ lọ si Danieli ori keji, o si yaa lẹnu jọjọ bi asọtẹlẹ naa ṣe wa si imuṣẹ rẹgi, gẹgẹ bi o ti ri ninu akọsilẹ opitan. Eyi jẹ ẹri si imisi Iwe Mimọ, ti o jẹ idakọro fun laarin ewu igba ikẹyin rẹ. Ikọni iyemeji nipa otitọ ọrọ Ọlọrun ko tẹ lọrun mọ, nipa kikọ ẹkọ Bibeli ati wiwa imọlẹ si, lẹyin igba diẹ, o ri igbagbọ tootọ.

Bi o ti n tẹsiwaju ninu iwadi rẹ nipa awọn isọtẹlẹ, o ri wipe wiwa Oluwa ti sunmọ etile. Bi otitọ nla yii ti lọwọ tó ati bi o ti ṣe pataki to wọ ọ lọkan, o fẹ lati mu tọ awọn eniyan lọ; ṣugbọn igbagbọ ti o wọpọ wipe ohun ijinlẹ ni awọn isọtẹlẹ Danieli, ati wipe ko le yeni jẹ idena nla fun. Nikẹyin, o pinu—bi Farel ti ṣe ṣaaju rẹ ni wiwaasu ni Geneva—lati bẹrẹ pẹlu awọn ọmọde, nipasẹ eyi, o ni ireti wipe yoo sọ ifẹ awọn obi wọn ji.

Nikẹyin, o sọ nipa iṣẹ rẹ yii pe: “Mo fẹ ki awọn eniyan o gbọ mi, ki i ṣe wipe ko ṣe pataki, ṣugbọn lodi si eyi, bi o ti niye lori to ni o jẹ ki n waasu rẹ ni ọna ti yoo fi ye wọn, ti mo si fi n kọ awọn ọmọ wọn. Mo fẹ ki wọn gbọ mi, mo si bẹru wipe wọn ki yoo gbọ bi mo ba kọkọ sọ ọ fun awọn agbalagba.” “Nitori naa mo pinu lati lọ ba awọn ti wọn kere julọ. Mo ko awọn ọmọde jọ; bi ẹgbẹ naa ba pọ si, bi wọn ba feti silẹ, ti inu wọn ba dun si, ti wọn si ni ifẹ si, ti o ye wọn, ti wọn tun le ṣe alaye koko ọrọ naa, o damiloju wipe laipẹ maa ni ẹgbẹ keji, ti awọn agbalagba yoo si ri wipe o ṣe pataki lati joko kẹkọ. Nigba ti a ba ṣe eyi, a ti ṣe aṣeyọri.”

Akitiyan rẹ yọri si rere. Bi o ti n ba awọn ọmọde sọrọ, awọn agbalagba n wa feti silẹ. Inu gbọngan ile ijọsin kun fun awọn olugbọ. Lara wọn ni awọn ọmọwe ati oloye, alejo ati ajeji ti wọn wa bẹ Geneva wo; bayii ni a ṣe gbe iṣẹ iranṣẹ naa lọ si ilẹ miran.

Aṣeyọri rẹ yii fun ni imoriya, Gausen wa tẹ awọn ẹkọ rẹ jade pẹlu ireti wipe yoo jẹ ki awọn ijọ ti n sọ ede French o kọ nipa awọn iwe isọtẹlẹ. Gausen sọ pe, “Lati tẹ awọn ẹkọ ti a fun awọn ọmọde jade, jẹ lati sọ fun awọn agbalagba ti wọn ṣá iru awọn iwe bẹẹ tì labẹ irọ wipe wọn ko le yeni wipe, ‘Bawo ni wọn ko file yeni, nigba ti wọn le ye awọn ọmọ yin?’” O fi kun wipe, “Mo ni ifẹ ọkan nla lati jẹ ki imọ asọtẹlẹ yii o di gbajugbaja laarin awọn ọmọ ijọ wa bi o ba ṣe e ṣe.” “Ni tootọ, bi mo ti rii si, ko si ẹkọ kan ti o le dahun si ibeere akoko yii ju yẹn lọ.” Nipasẹ eyi ni a fi le mura silẹ fun ewu ti o sunmọ etile, ati lati wọna ati lati duro fun Jesu Kristi.”

Bi o tilẹ jẹ wipe o jẹ ọkan lara awọn oniwaasu ni ede French ti o tayọ, ti a tun fẹran, lẹyin igba diẹ, a daa duro ninu iṣẹ alufa, ẹṣẹ rẹ si ni wipe dipo iwe ikọni ijọ, iwe akọsilẹ ọgbọn ori eniyan lasan ti ko ni igbagbọ tootọ, o lo Bibeli lati kọ awọn ọdọ. Lẹyin eyi, o di olukọ ni ile ẹkọ nipa ọrọ Ọlọrun, ni ọjọ aiku o tẹsiwaju ninu iṣẹ rẹ gẹgẹ bi olukọ, o n kọ awọn ọmọde lati inu Iwe Mimọ. Awọn eniyan nifẹ pupọpupọ si awọn iṣẹ rẹ lori asọtẹlẹ. Lati ipo ọjọgbọn rẹ, lati ile itẹwe, ati ninu iṣẹ ti o fẹran julọ gẹgẹ bi olukọ awọn èwe, o tẹsiwaju fun ọpọ ọdun lati ko ipa ti o pọ ti o si n ṣiṣẹ lati pe akiyesi ọpọlọpọ si kikọ nipa awọn asọtẹlẹ eyi ti o fihan wipe wiwa Oluwa sunmọ etile.

Ni Scandinavia a ṣe iwaasu nipa iṣẹ iranṣẹ ipadabọ pẹlu, awọn eniyan si nifẹ si. Ọpọlọpọ ni wọn ji dide kuro ninu aabo aibikita wọn ti wọn jẹwọ, ti wọn si n kọ ẹṣẹ wọn silẹ, ti wọn si n wa idariji ni orukọ Kristi. Ṣugbọn awọn alufa ijọ ilu tako ẹgbẹ naa, nipasẹ wọn a sọ diẹ lara awọn ti wọn n waasu rẹ sinu ọgba ẹwọn. Ni ọpọlọpọ ibi, bayii ni a ṣe pa awọn ti wọn n waasu ipadabọ Oluwa lẹnu mọ, o si tẹ Ọlọrun lọrun lati rán iṣẹ naa jade ni ọna ti o yanilẹnu, nipasẹ awọn ọmọde. Nitori ti wọn jẹ majẹsin, ofin ilu ko de wọn, a si gba wọn laaye lati waasu laisi idiwọ.

Ẹgbẹ gbajugbaja laarin awọn ti ko lọrọ, ni ibugbe awọn otoṣi ti wọn jẹ oṣiṣẹ ni awọn eniyan n pejọ pọ si lati gbọ ikilọ naa. Awọn ọmọde oniwaasu naa jẹ otoṣi. Diẹ lara wọn ko ju ọmọ ọdun mẹfa si mẹjọ lọ; nigba ti igbesi aye wọn jẹri si wipe wọn fẹran Olugbala, ati wipe wọn ṣe akitiyan lati gbe ni igbọran si ofin mimọ Ọlọrun, wọn ko ni ọgbọn ati agbara ti o ju ti ẹlẹgbẹ wọn lọ. Ṣugbọn nigba ti wọn ba duro niwaju awọn eniyan, o han kedere wipe agbara ti n lo wọn ki i ṣe lasan. Ohùn ati iṣesi wọn yatọ, pẹlu agbara mimọ wọn ṣe ikilọ nipa idajọ, nipa lilo awọn ọrọ Iwe Mimọ: “Bẹru Ọlọrun ki ẹ si fi ogo fun; nitori ti wakati idajọ Rẹ de.” Wọn ba ẹṣẹ awọn eniyan wi, ki i ṣe wipe wọn tako iwa ibajẹ ati iwa ipa nikan, ṣugbọn wọn ba ifẹ aye ati ifaṣeyin wi, wọn si kilọ fun awọn olugbọ wọn lati yara kankan sa kuro ninu ibinu ti n bọ.

Awọn eniyan gbọ pẹlu iwariri. Ẹmi Ọlọrun ti n bani wi ba ọkan wọn sọrọ. Ọpọ ni wọn yẹ Iwe Mimọ wo pẹlu ifẹ tuntun, ti o jinlẹ, awọn alaileko-ara-ẹni-nijanu ati awọn oniwa ibajẹ yipada, awọn yoku fi iwa aisootọ wọn silẹ, isẹ ti wọn ṣe farahan to bẹẹ gẹẹ, ti awọn alufa ijọ ilu fi gba wipe ọwọ Ọlọrun wa ninu ẹgbẹ yii.

O jẹ ifẹ Ọlọrun lati sọ iroyin wiwa Olugbala ni awọn orilẹ ede Scandinavia; nigba ti a si pa awọn ojisẹ Rẹ lẹnu mọ, O fi Ẹmi Rẹ si ori awọn ọmọde, ki a baa le ṣe isẹ naa. Nigba ti Jesu sunmọ Jerusalẹmu ti awọn ero ti n yọ tẹle pẹlu ariwo isẹgun, ti wọn n ju imọ ọpẹ, ti wọn si n kigbe si Ọmọ Dafidi, awọn ojowu Farisi sọ fun ki o pa wọn lẹnu mọ; ṣugbọn Jesu dahun wipe amuṣẹ isọtẹlẹ ni gbogbo nnkan wọnyi, ati wipe bi awọn wọnyi ba pa ẹnu wọn mọ, awọn okuta yoo kigbe jade. Ihalẹ awọn alufa ati alaṣẹ jẹ ki ẹru o ba awọn eniyan, ti wọn si dakẹ ikede ayọ wọn bi wọn ti n wọ igboro Jerusalẹmu; ṣugbọn awọn ọmọde ti wọn wà ninu gbọngan tẹmpili fi orin sẹnu, wọn si n fi imọ ọpẹ wọn, wọn n kigbe: "Hosanna si Ọmọ Dafidi!" Matiu 21:8—16. Nigba ti awọn Farisi, ti inu wọn bajẹ jọjọ sọ fun, "Ṣe o gbọ ohun ti awọn wọnyi n sọ?" Jesu dahun, "Bẹẹni; ẹyin ko ha ka wipe, Lẹnu awọn ọmọde ati ọmọ ọmu ni iwọ ti mú iyin pé?" Bi Ọlọrun ti ṣisẹ nipasẹ awọn ọmọde ni akoko wiwa Kristi ni akọkọ, bẹẹ gẹgẹ ni O ṣisẹ nipasẹ wọn ni fifunni ni isẹ iranṣẹ ti ipadabọ Rẹ lẹẹkeji. Ọrọ Ọlọrun nilati wa si imuṣẹ, ki a baa le kede wiwa Olugbala fun gbogbo eniyan ati ede ati orilẹ ede.

William Miller ati awọn alabaṣiṣẹpọ rẹ ni a fifun lati waasu ikilọ naa ni Amẹrika. Orilẹ ede yii di aarin gungun fun ẹgbẹ nla ti ipadabo. Nibi ni asọtẹlẹ isẹ iranṣẹ angẹli akọkọ ti ni imuṣẹ julọ. A gbe awọn iwe Miller ati ti awọn akẹgbẹ rẹ lọ si ilẹ jijina réré. Nibikibi ti awọn ajiyinrere ba de ni gbogbo aye, nibẹ ni a ran iroyin ayọ ti ipadabọ kankan Kristi si. A ran isẹ iranṣẹ ti iyinrere ainipẹkun lọ kaakiri: "Bẹru Ọlọrun, ki ẹ si fi ogo fun; nitori ti wakati idajọ Rẹ de."

Ẹri asọtẹlẹ ti o dabi ẹnipe o n tọka si wiwa Kristi ni asiko ọgbin 1844 wọ ọkan awọn eniyan lọ. Bi isẹ iranṣẹ naa ti n lọ lati ipinlẹ de ipinlẹ, ni ibi gbogbo ni ifẹ awọn eniyan ti sọji. Ọpọlọpọ ni wọn gbagbọ wipe ironu nipa akoko isọtẹlẹ tọna, wọn fi igberaga ọkan wọn silẹ, wọn si fi tayọtayọ gba otitọ. Awọn alufa miran fi ero ati igbagbọ adamọ wọn silẹ, wọn fi owo osu ati ijọ wọn silẹ, wọn si parapọ lati kede wiwa Jesu. Awọn alufa ti wọn gba isẹ iranṣẹ yii kere niye; nitori naa awọn ọmọ ijọ ni a gbe e lé lọwọ. Awọn agbẹ fi oko wọn silẹ, awọn onisẹ ọwọ fi irin isẹ wọn silẹ, awọn onisowo fi okoowo wọn silẹ, awọn osisẹ fi ipo wọn silẹ; sibẹ iye awọn osisẹ kere niye bi a ba ṣe afiwe rẹ pẹlu isẹ ti wọn nilati ṣe. Ipo awọn ijọ ti ko mọ Ọlọrun, ati aye ti o wa ninu

iwa ẹṣẹ di ẹru wuwo le ọkan awọn alóre otitọ, wọn si mọọmọ fi ara da wahala, aini ati ijiya, ki wọn ba le pe awọn eniyan si ironupiwada si igbala. Lootọ Satani tako wọn, ṣugbọn iṣẹ naa tẹsiwaju titi ti ọgọọrọ awọn eniyan fi gba otitọ nipa ipadabọ.

Ni ibi gbogbo ni a ti gbọ ẹri naa, ti n kilọ fun ẹlẹṣẹ, ati olufẹ aye ati ọmọ ijọ lapapọ lati sa kuro ninu ibinu ti n bọ. Bi Johanu Onitẹbọmi, aṣaaju fun Kristi, awọn oniwaasu gbe aaké lé gbongbo igi naa, wọn si rọ gbogbo eniyan lati so èso ti o yẹ fun ironupiwada. Ìpè kánkán wọn yatọ patapata si idaniloju alaafia ati aabo ti a n gbọ lati ori pẹpẹ iwaasu awọn ijọ; nibikibi ti a ba ti funni ni iṣẹ iranṣẹ naa, o n mi awọn eniyan lọkan. Ẹri ailabula ti Iwe Mimọ, ti agbara Ẹmi Mimọ mú wálé, fa igbagbọ eyi ti o ṣe wipe iwọnba eniyan diẹ ni wọn le tako o. Awọn afẹnuṣẹsin taji kuro ninu aabo eke wọn. Wọn ri ifaseyin wọn, ifẹran aye ati aigbagbọ wọn, igberaga ati imọ-ti-ara-ẹni-nikan wọn. Ọpọ ni wọn wa Oluwa pẹlu ironupiwada ati irẹraẹnisilẹ. Ifẹ ti o ti rọ mọ aye fun igba pipẹ wa rọ mọ ọrun. Ẹmi Ọlọrun bàlé wọn, pẹlu ọkan ti o sẹrọ, wọn darapọ mọ awọn eniyan lati kede igbe naa: “Bẹru Ọlọrun, ki ẹ si fi ogo fun; nitori ti wakati idajọ Rẹ de.”

Awọn ẹlẹṣẹ beere pẹlu ẹkun: “Kini ki n ṣe lati le ri igbala?” Awọn ti igbesi aye wọn kun fun aiṣootọ n fẹ lati ṣe atunṣe. Gbogbo awọn ti wọn ri alaafia ninu Kristi fẹ ki awọn miran o pin ninu ibukun naa. Ọkan awọn obi yi si awọn ọmọ wọn, ọkan awọn ọmọ yi si awọn obi. Idena igberaga ati àìdásíni kuro lọna. A ṣe ijẹwọ ẹṣẹ latọkanwa, ti awọn ara ile si n ṣiṣẹ fun igbala awọn ti wọn sun mọ wọn, ati ti awọn ololufẹ wọn. Ni ọpọ igba ni a maa n gbọ adura tọkantọkan nitori ẹlomiran. Ni ibi gbogbo ni awọn eniyan ti wa ninu ẹdun ọkan ti wọn n bẹbẹ pẹlu Ọlọrun. Ọpọ ni wọn jijakadi ni gbogbo oru ninu adura fun idaniloju wipe a ti dari ẹṣẹ wọn ji, tabi fun iyipada ara ile tabi alabagbe wọn.

Orişirişi eniyan ni wọn n lọ si ipade awọn Onireti. Awọn ọlọrọ ati awọn otoṣi, ẹni giga ati ẹni irẹsilẹ, lati ibi iṣẹ gbogbo ni wọn ti n wọna lati gbọ ikọni nipa ipadabọ funra wọn. Oluwa dí ẹmi atako lọwọ nigba ti awọn iranṣẹ Rẹ n ṣe alaye idi fun igbagbọ wọn. Ni igba miran, irin iṣẹ naa a jẹ alailagbara; ṣugbọn Ẹmi Ọlorun fun otitọ ni agbara. Wọn ni imọlara iwapẹlu awọn angẹli mimọ ninu awọn apejọ wọnyi, ti ọpọlọpọ si n darapọ mọ awọn onigbagbọ lojoojumọ. Bi a ti n ṣe alaye awọn ẹri nipa ipadabọ Kristi laipẹ, awọn ero a tẹti silẹ si awọn ọrọ mimọ naa. O dabi ẹnipe ọrun ati aye pade ara wọn. Awọn ọdọ ati ogbó ni imọlara agbara Ọlọrun. Awọn eniyan n lọ si ile wọn pẹlu iyin lẹnu wọn, ti ìró ayọ si n gba aṣalẹ kan. Ko si ẹni ti o lọ si awọn ipade naa ti yoo gbagbe awọn iṣẹlẹ ti wọn muni lọkan jọjọ naa.

Kikede akoko kan pato fun wiwa Kristi mu atako wa lati ọdọ ọpọ awọn eniyan, ni awujọ, lati ọdọ awọn alufa lori pẹpẹ iwaasu titi de ọdọ ẹlẹṣẹ alaibikita julọ. Awọn ọrọ asọtẹlẹ wa si imuṣẹ: “Ni igba ikẹyin awọn ẹlẹgan yoo wà, wọn yoo maa rin ninu ifẹkufẹ ara wọn, ti wọn yoo si wipe, Nibo ni ileri wiwa Rẹ gbé wà? nitori lati igba ti awọn baba ti sun, ohun gbogbo tẹsiwaju gẹgẹ bi wọn ti wà rí lati ibẹrẹ dida aye.” 2 Peteru 3:3, 4. Ọpọ ti wọn sọ pe wọn fẹran Olugbala, ni wọn sọ wipe wọn ko ni atako si ikọni nipa bibọ lẹẹkeji, ṣugbọn wọn ko faramọ dida akoko kan pato. Ṣugbọn oju Ọlọrun ti o n ri ohun gbogbo mọ ọkan wọn. Wọn ko fẹ gbọ nipa wiwa Kristi lati ṣe idajọ aye ninu ododo. Wọn jẹ ọmọ ọdọ alaisootọ, iṣẹ wọn ko le la ibẹwo Ọlọrun to n yẹ ọkan wo kọja, wọn bẹru lati pade Ọlọrun wọn. Bi awọn Ju ni akoko wiwa Kristi ni akọkọ, wọn ko ṣetan lati ki Jesu kaabọ. Kii ṣe wipe wọn kọ lati tẹti si alaye lati inu Bibeli nikan, ṣugbọn wọn fi awọn ti n wọna fun Oluwa ṣẹsin. Satani ati awọn angẹli rẹ yọ, wọn tun sọ egun wọn niwaju Kristi ati awọn angẹli mimọ wipe awọn ti wọn pe ara wọn ni eniyan Rẹ ni ko ni ifẹ pupọ fun, wọn ko si reti ifarahan Rẹ.

“Ko si ẹni ti o mọ ọjọ tabi wakati” ni koko ọrọ ti awọn ti wọn ko gba igbagbọ nipa ipadabọ saba maa n lo. Iwe Mimọ sọ wipe: “Ni ti ọjọ ati wakati naa, ko si ẹni ti o mọ ọ, ani awọn angẹli ọrun pẹlu, ayafi Baba Mi nikan.” Matiu 24:36. Awọn ti wọn n wọna fun Oluwa ṣe alaye ẹsẹ yii ni ọna ti o yè kooro, ti o si ba ara wọn mu, wọn si ṣe afihan bi awọn alatako ṣe n ṣi i lo. Kristi sọ ọrọ naa ninu ifọrọwerọ manigbagbe pẹlu awọn ọmọ ẹyin Rẹ lori oke Olifi lẹyin ti o kuro ninu tẹmpili fun igba ikẹyin. Awọn ọmọ ẹyin Rẹ beere pe: “Kini yoo jẹ ami wiwa Rẹ, ati ti opin aye?” Jesu fun wọn ni awọn ami, O tun sọ pe: “Nigba ti ẹyin ba ri nnkan wọnyi, ki ẹ mọ wipe o sunmọ etile, ani lẹnu ilẹkun.” Ẹsẹ 3, 33. A ko gbọdọ jẹ ki ọrọ Kristi kan o tako ekeji. Lootọ ko si ẹni ti o mọ ọjọ tabi wakati wiwa Rẹ, a kọ wa, a si fẹ ki a mọ nigba ti o ba sunmọ etile. A tun sọ fun wa wipe kikọ ikilọ Rẹ ati kikọ tabi ṣiṣe ainaani lati mọ nigba ti bibọ Rẹ ba sunmọ, yoo kun fun ewu fun wa gẹgẹ bi o ti ri fun awọn ti wọn gbe ni akoko Noah bi wọn ko ti ṣe mọ igba ti ikun omi de. Owe inu ẹsẹ kan naa, ti o fi ọmọ ọdọ olootọ we alaisootọ, ti o sọ nipa iparun ẹni ti o wi ninu ọkan rẹ pe, “Oluwa mi fa bibọ Rẹ seyin,” fihan bi Kristi yoo ti ka awọn ti O bá ba ti wọn n wọna, ti wọn si n fi wiwa Rẹ kọni si, ti yoo si fun wọn ni ere, ati bi o ti ka awọn ti wọn sẹ Ẹ si. “Nitori naa ẹ maa ṣọna” ni O wi. “Ibukun ni fun ọmọ ọdọ naa, ti Oluwa rẹ ba ti n ṣe bẹẹ nigba ti o ba de.” Ẹsẹ 42, 46. “Nitori naa bi o ko ba ṣọna, Emi yoo de si ọ bi ole, iwọ ki yoo si mọ wakati ti Emi yoo de si ọ.” Ifihan 3:3

Pọlu sọ nipa ẹgbẹ ti ifarahan Oluwa yoo ba ni aimurasilẹ. “Ọjọ Oluwa yoo wa bi ole ni oru. Nitori nigba ti wọn ba n sọ pe, Alaafia ati aabo; nigba naa ni iparun yoo de ba wọn lojiji; . . . wọn ki yoo le sa asala.” Ṣugbọn o fikun, fun awọn ti wọn ṣe igbọran si ikilọ Olugbala: “Ẹyin ara, ẹ ko si ninu okunkun, ti ọjọ naa i ba fi ba yin gẹgẹ bi ole. Ẹyin jẹ ọmọ imọlẹ ati ọmọ ọsan: a ki i ṣe ti oru tabi ti okunkun.” 1 Tẹsalonika 5:2—5.

Bayii ni a ṣe fihan wipe Iwe Mimọ ko fi aaye gba ki eniyan o wa ni aimọkan nipa bi wiwa Oluwa ti n sun mọle. Awọn ti wọn n wa awawi lati kọ otitọ silẹ kọ eti ọgbọin si alaye yii, ti ọrọ yii “ko si ẹni ti o mọ ọjọ tabi wakati” si n dún lọ lẹnu awọn ẹlẹgan, ani, ati awọn ti wọn pe ara wọn ni ojiṣẹ Kristi. Bi awọn eniyan ti n taji, ti wọn n beere nipa ọna igbala, awọn olukọ ẹsin duro si aarin wọn ati otitọ, wọn n wọna lati fi ọkan wọn balẹ nipa siṣi ọrọ Ọlọrun tumọ. Awọn alore alaiṣootọ fọwọsowọpọ ninu iṣẹ atanniiẹ nla ni, wọn n kigbe, Alaafia, alaafia, nigba ti Ọlọrun ko kede alaafia, ọpọ ni wọn kọ lati wọ ijọba Ọlọrun, ti wọn tun n di awọn ti wọn n wọle lọwọ. A o beere ẹjẹ awọn ọkan wọnyi lọwọ wọn.

Awọn ọmọ ijọ ti ko lọrọ ti wọn si jẹ onifọkansin ni wọn kọkọ gba iṣẹ iranṣẹ yii. Awọn ti wọn kọ ẹkọ Bibeli funra wọn ri bi ọna ti o gbajugbaja lati tumọ asọtẹlẹ ko ti ba Bibeli mu to; nibikibi ti awọn alufa ko ba ti dari awọn eniyan, nibikibi ti wọn ba ti le wa inu Bibeli funra wọn, a nilati fi ikọni ti ipadabọ we Iwe Mimọ lasan ni lati le fi idi otitọ rẹ mulẹ.

Awọn arakunrin alaigbagbọ ṣe inunibini si ọpọlọpọ. Lati ma baa fi ipo wọn ninu ijọ silẹ, diẹ gba lati maṣe polongo ireti wọn; ṣugbọn awọn miran gba wipe igbọran wọn si Ọlọrun ko fi aaye gba wọn lati fi otitọ ti a fi si ikawọ wọn pamọ. Ki i ṣe awọn diẹ ni a le kuro ninu ijọ, ki si i ṣe fun idi miran bikoṣe wipe wọn gbagbọ ninu wíwá Kristi. Awọn ọrọ woli yii ṣe iyebiye si awọn ti wọn fi ara da idanwo igbagbọ: “Awọn arakunrin yin ti wọn korira yin, ti wọn le yin sita nitori orukọ Mi, sọ pe, Jẹ ki a fi ogo fun Oluwa: ṣugbọn yoo fi ara han fun ayọ yin, oju yoo si ti wọn.” Aisaya 66:5.

Awọn angẹli Ọlọrun n wo ayọrisi iṣẹlẹ naa pẹlu ifẹ ọkan ti o jinlẹ. Nigba ti awọn ijọ kọ iṣẹ iranṣẹ naa silẹ, awọn angẹli yipada pẹlu ibanujẹ. Ṣugbọn ọpọ ni a koi tii danwo pẹlu otitọ ti ipadabọ. Ọpọlọpọ ni awọn ọkọ, iyawo, obi, tabi ọmọ ṣi lọna, ti a jẹ ki wọn gbagbọ wipe ẹṣẹ ni lati tẹti si ẹkọ odi ti awọn Onireti fi n kọni. A ran awọn angẹli lati maa ṣọ awọn ọkan wọnyi, nitori imọlẹ miran yoo tan si wọn lati itẹ Ọlọrun wa.

Pẹlu ifẹ ọkan ti ko ṣe e fẹnu sọ, awọn ti wọn gba iṣẹ iranṣẹ naa n wọna fun wiwa Olugbala wọn. Akoko ti wọn n reti lati pade Rẹ

sunmọ. Wọn n sunmọ akoko yii pẹlu idakẹjẹ mimọ. Wọn sinmi ninu ibaṣepọ didun pẹlu Ọlọrun, akoso alaafia ti yoo jẹ ti wọn ninu aye didan ti n bọ. Ko si ẹni ti o ni iriri ireti ati igbẹkẹle yii ti o le gbagbe awọn wakati iyebiye ti wọn fi duro. Fun awọn ọṣẹ diẹ ṣaaju akoko yii, a pa iṣẹ aye ti fun ọpọ akoko. Awọn onigbagbọ tooto ṣe ayẹwo gbogbo ero ati ifẹ ọkan wọn finifini ayafi bi ẹnipe wọn wa lori ibusun iku wọn ati, ni wakati diẹ si, wọn yoo pa oju wọn de si iṣẹlẹ inu aye yii. Ko si ẹni ti o rán “aṣọ igbasoke”; ṣugbọn gbogbo wọn mọ wipe wọn ni idaniloju lati inu ọkan wa boya wọn ṣetan lati pade Olugbala; aṣọ funfun wọn ni ọkan mimọ—iwa ti a fọmọ kuro ninu ẹṣẹ nipasẹ ẹjẹ Kristi. I ba ti dara to bi awọn eniyan Ọlọrun ba si ni iru ẹmi iyẹ ọkan wo, iru igbagbọ gbigbona ti ko le yẹ kan naa. Bi o ba ṣe wipe wọn tẹsiwaju lati rẹ ara wọn silẹ niwaju Oluwa, ti wọn si n gbe ẹbẹ wọn wa siwaju itẹ aanu ni, ìrírí wọn i ba kun ju eyi ti wọn ni nisinsinyii lọ. Adura ko pọ mọ, imọlara ẹṣẹ ko pọ mọ, aisi igbagbọ ti o wa laaye jẹ ki ọpọ o ṣe aini oore ọfẹ ti Olugbala wá funni ni ọpọ yanturu.

Ọlọrun fẹ dan awọn eniyan Rẹ wo. O da ọwọ bo aṣiṣe kan ninu kika awọn akoko isọtẹlẹ. Awọn Onireti ko ri aṣiṣe wọn, bẹẹni eyi ti o loye julọ ninu awọn alatako wọn ko ri i. Awọn alatako wọn sọ pe: “Bi ẹ ti ṣe ka akoko isọtẹlẹ tọna. Iṣẹlẹ nla kan fẹ ṣẹlẹ; ṣugbọn ki i ṣe ohun ti Mr. Miller n sọ, iyipada aye ni, ki i si i ṣe ipadabọ Kristi lẹẹkeji.”

Asiko ti wọn n reti kọja, Kristi ko farahan fun idande awọn eniyan Rẹ. Awọn ti wọn fi igbagbọ ati ifẹ tootọ wọna fun Olugbala wọn ri ijakulẹ kikoro. Sibẹ erongba Ọlọrun n wa si imuṣẹ; O n dan ọkan awọn ti wọn n kede wipe wọn n duro de wiwa Rẹ wo. Awọn kan wa laarin wọn ti o jẹ wipe ko si idi pataki kan ti o mu wọn gbagbọ bikoṣe ibẹru. Ijẹwọ igbagbọ wọn ko yi ọkan wọn tabi igbesi aye wọn pada. Nigba ti iṣẹlẹ ti wọn n reti ko ṣẹlẹ, wọn sọ wipe inu wọn ko bajẹ; wọn ko fi igba kan gbagbọ wipe Kristi yoo wa. Wọn wa lara awọn ti wọn kọkọ gan ibanujẹ awọn onigbagbọ tootọ.

Ṣugbọn Jesu ati gbogbo ogun ọrun n fi ifẹ ati ikaanu wo awọn ti a n dan wo ti wọn si jẹ olootọ, bi o tilẹ jẹ wipe wọn ri ijakulẹ. Bi o ba ṣe wipe a le ṣi iboju ti n bo aye àìrí kuro ni, a ba ri awọn angẹli ti wọn n ṣu bo awọn ọkan ti wọn duro ṣinṣin wọnyi, ti wọn n daabo bo wọn kuro lọwọ ọfa Satani.

21

Ikilọ Ti A Kọ Silẹ

Ni wiwaasu ikọni ti ipadabọ lẹẹkeji, William Miller ati awọn ẹmẹwa rẹ ṣiṣẹ pẹlu erongba lati ta awọn eniyan ji lati mura silẹ fun idajọ. Wọn wa ọna lati ta awọn ẹlẹsin ji si ireti tootọ ti ijọ ati sí bi wọn ti nilo iriri Kristẹni ti o jinlẹ tó; wọn ṣiṣẹ lati ta awọn ti koi tii ronupiwada ji si ojuṣe wọn lati yipada lọgan ki wọn si ronupiwada si ọdọ Ọlọrun. “Wọn ko ṣa ipa lati yi awọn eniyan pada sinu ẹgbẹ kankan ninu ẹsin. Nitori naa, won ṣiṣẹ laarin gbogbo awọn eniyan lai fọwọ kan eto tabi iṣesi wọn.”

Miller sọ wipe, “Ninu gbogbo iṣẹ mi, mi o ni ifẹ tabi ero lati da ijọ kankan silẹ lati inu awọn ijọ ti wọn wa nilẹ, tabi lati jẹ ki ọkan o jere lati ara ekeji. Ipinu mi ni lati ṣe gbogbo wọn loore. Bi o ba jẹ wipe gbogbo Kristẹni ni o yọ ninu ero ti wíwá Kristi, ati wipe ifẹ awọn ti ko wòye bi mo ti woye ko dinku si awọn ti wọn gba ikọni yii, mi o ro wipe a maa nilo lati ni ipade ọtọ. Erongba mi ni ifẹ lati yi awọn ọkan pada si Ọlọrun, lati sọ fun araye nipa idajọ ti n bọ, ati lati jẹ ki awọn eniyan o pese ọkan silẹ, eyi ti yoo jẹ ki wọn le pade Ọlọrun wọn pẹlu alaafia. Ọpọlọpọ awọn ti wọn yipada nitori iṣẹ mi darapọ mọ awọn ijọ ti wọn wa nilẹ tẹlẹ ni."

Nitori ti iṣẹ rẹ jẹ ki awọn ijọ o tẹsiwaju, a fi oju rere wo o fun igba diẹ. Ṣugbọn nigba ti awọn alufa ati adari ẹsin pinu lati tako ikọni nipa ipadabọ ti wọn si tẹ gbogbo ibeere lori ọrọ naa rì, ki i ṣe wipe wọn tako o lati ori pẹpẹ iwaasu nikan, ṣugbọn wọn ko fun awọn ọmọ ijọ wọn ni anfani lati lọ si ibi iwaasu ipadabọ lẹẹkeji, tabi sọ nipa ireti wọn ninu awọn ipade ijọ. Bayii ni awọn onigbagbọ ṣe ba ara wọn ni ipo idanwo nla ati iporuuru ọkan. Wọn fẹran ijọ wọn, wọn ko si ro lati kuro nibẹ;

ṣugbọn bi wọn ti n ri ti wọn n tẹ ẹri ọrọ Ọlọrun rì ti wọn tun n fi ẹtọ wọn lati ṣe ayẹwo asọtẹlẹ dun wọn, wọn ri wipe igbọran wọn si Ọlọrun ko gba wọn laaye lati gbọ ti ijọ. Wọn ko le gba awọn ti wọn n kọ ẹri ọrọ Ọlọrun silẹ gẹgẹ bi ara Kristi, “opo ati ipilẹṣẹ otitọ.” Nitori naa, wọn ri wipe wọn ko jẹbi bi wọn ba kuro ninu ijọ wọn. Ni igba ẹrun ni 1844, bi ẹgbẹrun lọna aadọta awọn eniyan ni wọn kuro ninu awọn ijọ.

Ni akoko yii, iyatọ nla farahan ninu ọpọlọpọ ijọ ni United States. Fun ọpọ ọdun sẹyin, diẹdiẹ, awọn ijọ ti n tẹle iwa ati iṣesi aye, ti iná igbe aye ẹmi wọn si n jo ajoreyin; ṣugbọn ni ọdun naa awọn ẹri wà ti wọn fihan wipe lojiji gbogbo ilẹ naa ni ifasẹyin ti fẹrẹ bá tán. Nigba ti ko si ẹni ti o le sọ ohun ti o fa a, ati ile itẹwe ati lati ori pẹpẹ iwaasu ni a ti fiyesi, ti a tun n sọ nipa iṣẹlẹ naa.

Ni ipade awọn alagba ni Philadelphia, Mr. Barnes, ẹni ti o kọ iwe ti o gbajugbaja lori Bibeli ti o tun jẹ alufa ninu ọkan lara awọn ijọ ti o tobi julọ ninu ilu naa “sọ wipe, oun ti wà ninu iṣẹ alufa fun ogun ọdun, koi ti i ṣẹlẹ ri, titi fi di igba onjẹ alẹ Oluwa ti o kẹyin, ki oun ṣe eto naa laigba awọn eniyan sinu ijọ. Ṣugbọn bayii, ko si isọji, ko si iyipada, ko si idagbasoke kan gboogi ninu oore ọfẹ ti a le tọkasi ninu awọn olujọsin, ko si si ẹni ti o lọ ba ni ibi ikẹkọ rẹ lati ba jiroro nipa igbala ọkan wọn. Bi oko òwò ti n gberu si, ti ọjọ iwaju eto ìtajà ati ile iṣẹ n dan si, bẹẹ ni ifẹ aye n pọ si. Bayii ni o ṣe ri ninu gbogbo ijọ.”

Ni oṣu February ọdun kan naa, Ọjọgbọn Finney ti Oberlin College sọ pe: “O ye wa kedere wipe ni akotan, gbogbo ijọ Protestant ti orilẹ ede wa, ni wọn ko kọbi ara si tabi ni wọn ṣe atako si gbogbo atunṣe iṣesi ti akoko yii. Awọn kan wa ti wọn yatọ, ṣugbọn awọn wọnyi ko pọ to lati yi koko ọrọ naa pada kuro ni akotan. A tun ni awọn koko ọrọ miran lati gbe e leyin: aisi ipa isọji ninu awọn ijọ. Aikọbi ara si ohun ti ẹmi ti fẹrẹ bo gbogbo ilẹ, ti o si wọpọ ni ọna ti o banilẹru; bayii ni gbogbo awọn iwe atẹjade awọn ijọ ni gbogbo ilẹ naa ṣe sọ. . . . O wọpọ ki awọn ọmọ ijọ o di olujọsin ọṣọ ara,—wọn fọwọsowọpọ pẹlu awọn alaiwabiọlọrun ninu ariya faaji, ijó ajọdun, ati bẹẹbẹẹlọ... Ṣugbọn a ko nilati fẹ ọrọ ti n dunni lọkan yii loju. Ẹ jẹ ki a mọ wipe ẹri naa pọ, wọn si ṣubowa mọlẹ, eyi ti o fihan wipe, ni akotan, awọn ijọ, (pẹlu ẹdun ọkan,) ti dibajẹ. Wọn ti jinna réré sí Oluwa, Oun si ti ya ara Rẹ kuro ni ọdọ wọn.”

Onkọwe kan ninu Religious Telescope jẹri wipe: “A koi tii ri ifasẹyin ninu ijọ gẹgẹ bi a ti ri ni akoko yii ri. Ni tootọ, o yẹ ki ijọ o taji, ki o si mọ okunfa ijiya yii; nitori bi ijiya ni o ṣe yẹ ki gbogbo ẹni ti o fẹ Sioni o ri. Nigba ti a ba wòye bi iyipada tootọ ti kere to, ati aironupiwada, ati bi ọkan awọn ẹlẹṣẹ ti yigbi tó, lairotẹlẹ, a fẹrẹ le kigbe wipe, ‘Ṣe Ọlọrun ti gbagbe lati fi oore ọfẹ han ni? tabi, njẹ ilẹkun aanu ti tì ni?’”

Iru ipo yii kii waye laisi idi fun ninu ijọ funra rẹ. Okunkun ẹmi ti o n ṣubu sori awọn orilẹ ede, awọn ijọ, ati sori ẹnikọọkan, kii ṣe wipe Ọlọrun mọọmọ dawọ iranlọwọ oore ọfẹ Rẹ duro, ṣugbọn nitori pe eniyan ko naani imọlẹ ọrun, o si ti kọ ọ silẹ. Apẹẹrẹ otitọ ti o han kedere yii ni a ri ninu itan awọn Ju ni akoko Kristi. Nipa bi wọn ti gbaju mọ aye ti wọn si gbagbe Ọlọrun ati ọrọ Rẹ, iyè wọn ṣokunkun, ọkan wọn kun fun ifẹ aye ati ifẹkufẹ ara. Wọn wa ni aimọkan nipa wiwa Mesaya, wọn si kọ Olugbala silẹ nitori igberaga ati aigbagbọ wọn. Ni asiko yii gan an, Ọlọrun ko kuku tii gé orilẹ ede Ju kuro ninu imọ ati ikopa ninu ibukun igbala. Ṣugbọn awọn ti wọn kọ otitọ silẹ sọ gbogbo ifẹ fun ibukun Ọlọrun nu. Wọn ti fi "okunkun pe imọlẹ ati imọlẹ pe okunkun," titi ti imọlẹ ti o wa ninu wọn fi di okunkun; okunkun naa ti ṣe pọ to!

O tẹ Satani lọrun ki awọn eniyan o ni afarawe ẹsin, ṣugbọn ki wọn ma ni ẹmi agbara iwabiọlọrun. Nigba ti wọn kọ iyinrere silẹ, awọn Ju tẹsiwaju lati fi itara di awọn aṣa igba atijọ mú, wọn fi gbogbo agbara ya orilẹ ede wọn sọtọ, nigba ti awọn funra wọn mọ wipe Ọlọrun ko si ni aarin wọn. Asọtẹlẹ Danieli tọka kedere si asiko wiwa Mesaya, o tun sọ nipa iku Rẹ, wọn ko jẹ ki awọn eniyan o ṣe ayẹwo eleyi, nikẹyin, awọn rabbi fi ẹnikẹni ti o ba ṣe akitiyan lati ka akoko naa gégun. Pẹlu ifọju ati aironupiwada, fun ọpọ ọdun, awọn eniyan Israeli duro laikọbi ara si ẹbun oore ọfẹ igbala, wọn ko fi iye si awọn ibukun iyinrere, ikilọ ọlọwọ ti o si lẹru nipa ewu ti o wa ninu kikọ imọlẹ lati ọrun silẹ.

Nibikibi ti iru iṣẹlẹ yii ba wa, iru atubọtan kan naa ni yoo tẹle. Ẹnikẹni ti o ba mọọmọ ṣe ọkan rẹ le nipa ojuṣe rẹ nitori pe o tako ifẹ ọkan rẹ, yoo padanu agbara lati mọ iyatọ laarin otitọ ati irọ. Iye rẹ a ṣokunkun, ẹri ọkan rẹ a yigbi, ọkan rẹ a le, yoo si yapa kuro ni ọdọ Ọlọrun. Ni ibi ti a ba ti gan, tabi kọ iṣẹ iranṣẹ otitọ ọrun silẹ, okunkun a bo ijọ naa mọlẹ; igbagbọ ati ifẹ a di tutu, iyapa ati arankan a bẹ silẹ. Awọn ọmọ ijọ a ko gbogbo ifẹ wọn sori ohun aye, ọkan awọn ẹlẹṣẹ a si yigbi ninu aironupiwada wọn.

A pète iṣẹ iranṣẹ angẹli akọkọ ti Ifihan 14, ti o kede wakati idajọ Ọlọrun ti o n pe awọn eniyan lati bẹru ki wọn si jọsin Rẹ, lati ya awọn eniyan Ọlọrun sọtọ kuro ninu ipa iwa ibajẹ aye ki o si tawọn ji lati ri ipo ifẹ aye ati ifaseyin ti wọn wa gan an. Ninu iṣẹ iranṣẹ yii, Ọlọrun ran ikilọ sinu ijọ, eyi ti o jẹ wipe bi wọn ba gba a, yoo ṣe atunṣe awọn iwa buburu ti n mu wọn pamọ kuro niwaju Rẹ. Bi o ba jẹ wipe wọn gba iṣẹ iranṣẹ lati ọrun, ti wọn tẹri ọkan wọn ba niwaju Oluwa, ti wọn fi tọkantọkan mura silẹ lati duro niwaju Rẹ ni, Ẹmi ati agbara Ọlọrun i ba fi ara han laarin wọn. Lẹẹkansi ijọ i ba de ipele alabukun ti iṣọkan, igbagbọ ati ifẹ ti o wa ni akoko awọn apostoli, nigba ti awọn onigbagbọ "ni ọkan kan

ati iye kan," ti "wọn fi igboya sọ ọrọ Ọlọrun," nigba ti "Oluwa n fi awọn ti a gbala kun ijọ lojoojumọ." Iṣe 4:32, 31; 2:47.

Bi awọn eniyan Ọlọrun yoo ba gba imọlẹ bi o ti n tan si wọn lati inu ọrọ Rẹ, wọn yoo de ipo iṣọkan eyi ti Kristi gbadura fun, eyi ti apostoli ṣe alaye rẹ bayii, "iṣọkan ti Ẹmi ninu akopọ alaafia." O sọ pe, "Ara kan ni n bẹ, ati Ẹmi kan, ani bi a ti pe yin ninu ireti kan ti ìpè yin; Oluwa kan, igbagbọ kan, itẹbọmi kan." Efesu 4:3—5.

Iru awọn ayọrisi alabukun ti awọn ti wọn gba iṣẹ iranṣẹ ipadabọ rí niyii. Wọn wa lati orişirişi ijọ, a bi idiwọ tí ijọ mu wa lulẹ; awọn ikọni ti wọn yatọ ni a pin si yẹlẹyẹlẹ; a kọ ireti ijọba ẹgbẹrun ọdun ninu aye yii silẹ, a ṣe atunṣe awọn ero ti ko tọna nipa ipadabọ lẹẹkeji, a gbá igberaga ati ibarẹ aye kuro; a ṣe atunṣe iwa ti ko tọ; awọn ọkan wa ni iṣọkan ninu ibaṣepọ ti o dun julọ, ifẹ ati ayọ si n jọba laisi idiwọ. Bi ikọni yii ba ṣe eyi fun awọn perete ti wọn gba a, bakan naa ni i ba ṣe ṣiṣẹ, bi gbogbo eniyan ba gba a.

Ṣugbọn lapapọ ijọ ko gba ikilọ naa. Awọn alufa wọn, ti wọn dabi alore "si awọn ọmọ Israeli," ni o yẹ ki wọn kọkọ ri ami wiwa Jesu, ṣugbọn wọn baku lati kẹkọ otitọ lati ara awọn ami akoko. Bi ireti ati ifẹ aye ti kun ọkan, ifẹ fun Ọlọrun ati igbagbọ ninu ọrọ Rẹ di tutu; nigba ti a waasu ikọni nipa ipadabọ, o ru ẹtanu ati aigbagbọ wọn soke lasan ni. Nitori pe awọn ọmọ ijọ (ki i si i ṣe awọn alufa) ni wọn ṣiṣẹ pupọ julọ ninu iwaasu naa wà lara awọn ohun ti wọn fi tako o. Bi igba atijọ, ẹri ọrọ Ọlọrun ti o han kedere ni a fi ibeere yii dahun si: "N jẹ ọkan ninu awọn alaṣẹ tabi awọn Farisi ti gbagbọ?" Nigba ti wọn ri bi o ti nira to lati tako koko ọrọ ti wọn mu jade lati inu awọn akoko isọtẹlẹ, ọpọ bu ẹnu àtẹ lu kikẹkọ nipa isọtẹlẹ, ti wọn si n kọni pe a ti sé awọn iwe isọtẹlẹ pa ati pe kò le yeni. Ọgọọrọ awọn eniyan ti wọn fi ọkan tan alufa wọn kọ lati tẹti si ikilọ naa; awọn miran, bi o tilẹ jẹ wipe wọn gbagbọ wipe otitọ ni, wọn kọ lati ṣe ijẹwọ rẹ, ki a ma baa "le wọn jade ninu sinagọgu." Iṣẹ iranṣẹ ti Ọlọrun ran fun idanwo ati ifọmọ ijọ fihan ni kedere bi ọpọlọpọ ti fi ifẹ wọn si inu ohun aye ju sí inu Kristi lọ. Ohun ti o so wọn pọ mọ aye lagbara ju onfa ti ọrun lọ. Wọn yan lati tẹti si ohùn ọgbọn aye, wọn si pẹyinda si iṣẹ iranṣẹ otitọ ti n yẹ ọkan wo.

Ni kikọ ikilọ angẹli akọkọ silẹ, wọn kọ ọna ti Ọrun là kalẹ fun imubọsipo wọn silẹ. Wọn gan iṣẹ iranṣẹ oloore ọfẹ ti i ba ṣe atunṣe iwa buburu ti o ya wọn kuro ni ọdọ Ọlọrun, pẹlu itara nla wọn lọ wa ibadọrẹ aye. Eyi ni ohun ti o fa ipo ifẹ aye, ifasẹyin, ati iku ẹmi ti o wa ninu awọn ijọ ni 1844.

Ninu Ifihan 14 iṣẹ iranṣẹ angẹli keji ni o tẹle iṣẹ iranṣẹ angẹli kini, ti o n kede wipe: "Babiloni wo, o wo, ilu nla ni, nitori ti o mu gbogbo

orilẹ ede mu ninu ọti waini ibinu agbere rẹ.” Ifihan 14:8. Ọrọ ti a pe ni “Babiloni” ni a mu lati inu “Babeli,” ti o tumọ si idarudapọ. A lo o ninu Bibeli lati ṣe akawe orişirişi ẹsin eke tabi eyi ti o yan apẹyinda. Ni Ifihan 17, a lo Babiloni lati tumọ si obinrin kan—akawe ti a lo ninu Bibeli ti o tumọ si ijọ, obinrin rere ni o tumọ si ijọ mimọ nigba ti obinrin pansaga tumọ si ijọ ti o yan apẹyinda.

Ninu Bibeli ibaṣepọ ti o jẹ mimọ ti o si nipọn ti o wa laarin Kristi ati ijọ Rẹ ni a fi igbeyawo ṣe akajuwe rẹ. Oluwa ti so awọn eniyan Rẹ pọ mọ ara Rẹ pẹlu majẹmu mimọ, O n ṣeleri lati jẹ Ọlọrun wọn, awọn naa si jẹjẹ lati jẹ ti Rẹ ani ti Rẹ nikan. O sọ pe: “Emi yoo gbe ọ ni aya titi lae; bẹẹ ni, Emi yoo gbe ọ ni aya ni ododo ati ni idajọ, ati ni ifẹ ati ni aanu.” Hosia 2:19. Ati pẹlu “Emi ti gbe ọ niyawo.” Jeremaya 3:14. Pọlu lo iru akajuwe kan naa ninu Majẹmu Tuntun nigba ti o sọ wipe: “Emi ti fi ọ mọ ọkọ kan, ki emi le fi ọ han fun Kristi bi wundia mimọ.” 2 Kọrintin 11:2.

Aiṣotitọ ijọ si Kristi nipa jije ki igbẹkẹle ati ifẹ rẹ o yi kuro ni ọdọ Rẹ, ti o wa jẹ ki ifẹ ohun aye o gba ọkan rẹ ni a fi wé titapa si majẹmu igbeyawo. Ẹṣẹ Israeli ni yiya kuro ni ọdọ Oluwa ni a ṣe alaye rẹ pẹlu apẹẹrẹ yii; ati ifẹ agbayanu ti Ọlọrun ti wọn ko naani ni a ṣe alaye rẹ ni ọna ti o wọnilọkan bayii: “Mo bura fun ọ, mo si da majemu pẹlu rẹ, ni Oluwa wi, iwọ si di temi.” “Iwọ si jẹ arẹwa jọjọ, iwọ si tobi di ijọba kan. Okiki rẹ si jade lọ si ọdọ awọn alaigbagbọ nitori ẹwa rẹ: nitori ti o pé nipasẹ ẹwa Mi, eyi ti mo fi si ọ lara. . . . Ṣugbọn iwọ gbẹkẹle ẹwa rẹ, iwọ si di pansaga nitori okiki rẹ.” “Bi iyawo ti n fi aiṣootọ kuro ni ọdọ ọkọ rẹ, bẹẹ gẹgẹ ni ẹyin ṣe aiṣootọ si mi, ẹyin ile Israeli, ni Oluwa wi;” “bi iyawo ti o ṣe agbere, ti o n tẹle ajeji dipo ọkọ rẹ!” Isikiẹli 16:8, 13—15, 32; Jeremaya 3:20.

Ninu Majẹmu Tuntun, iru ede ti o jọra bakan naa ni a lo fun Kristẹni ti o ba n wa ibadọre aye yii ju oju rere Ọlọrun lọ. Apostoli Jakobu wipe: “Ẹyin alagbere lọkunrin ati lobinrin, njẹ ẹyin ko mọ wipe ibarẹ aye, iṣọta ni si Ọlọrun? nitori naa, ẹnikẹni ti yoo ba jẹ ọrẹ aye yoo di ọta Ọlọrun.”

Obinrin (Babiloni) ti Ifihan 17 ni a ṣalaye wipe “o wọ aṣọ elése aluko, ati aṣọ ọgbọ, ti a fi wura ati pearli ati okuta olowo iyebiye ṣe lọṣọ, ti o ni ago wura ni ọwọ rẹ ti o kun fun eeri ati aimọ: . . . ati ni iwaju ori rẹ ni a kọ orukọ kan si, Ohun ijinlẹ, Babiloni nla, iya awọn panṣaga. Woli naa wipe: “Mo ri obinrin naa ti o mu ẹjẹ awọn eniyan mimọ yó, pẹlu ẹjẹ awọn ajẹriku fun Jesu.” Siwaju sii, a sọ wipe Babiloni jẹ “ilu nla ni, ti o n ṣakoso lori awọn ọba aye.” Ifihan 17:4—6, 18. Romu ni agbara ti o ṣakoso bi onroro lori awọn ọba ile Kristẹni fun ọpọ ọdun. Aṣọ ọgbọ ati elese aluko, wura ati okuta olowo iyebiye ati

pearli, fihan ni kedere ọla ati iwuga ti o ju ti awọn ọba lọ eyi ti Romu n jẹgbadun. Ko si si agbara miran ti a le sọ ni otitọ wipe “o mu ẹjẹ awọn eniyan mimọ yo” bi ijọ naa ti o fi iwa ika ṣe inunibini si awọn atẹle Kristi. A tun fi ẹsun ẹṣẹ ibaṣepọ ti ko bofinmu pẹlu “awọn ọba aye” kan Babiloni. Nipasẹ yiyapa kuro ni ọdọ Oluwa, ati ibaṣepọ pẹlu awọn alaigbagbọ ni o sọ ijọ Ju di panṣaga; Romu pẹlu ni biba ara rẹ jẹ ni ọna kan naa nipa wiwa atilẹyin agbara aye gba iru ibawi kan naa.

A sọ wipe Babiloni ni “iya awọn pansaga.” Awọn ọmọbinrin rẹ ni a yoo ṣe afihan wọn gẹgẹ bi awọn ijọ ti wọn dirọ mọ awọn ikọni ati aṣa rẹ, ti wọn si n tẹle apẹẹrẹ rẹ nipa kikọ otitọ ati ilana Ọlọrun silẹ, lati le ni ibaṣepọ ti ko bofin mu pẹlu aye. Iṣẹ iranṣẹ Ifihan 14, ti o kede iṣubu Babiloni nilati sọ nipa gbogbo ẹgbẹ ẹsin ti wọn fi igba kan jẹ mimọ, ṣugbọn ti wọn ti di eléeri. Nitori pe ikilọ idajọ ni o tẹle iṣẹ iranṣẹ yii, a nilati ṣe iwaasu rẹ ni akoko ikẹyin; nitori naa, ki i ṣe ijọ Romu nikan ni o bawi, nitori pe ijọ naa ti wà ni ipò iṣubu fun ọpọ ọdun. Siwaju sii, ni ori kejidinlogun iwe Ifihan, a pe awọn eniyan Ọlọrun lati jade kuro ninu Babiloni. Gẹgẹ bi ẹṣẹ yii ti sọ, opọlọpọ awọn eniyan Ọlọrun ni wọn yoo si wa ninu Babiloni. Ninu ẹgbẹ ẹsin wo ni a ti le ri pupọ ninu awọn atẹle Kristi loni? Laiṣe aniani, ninu orisirisi ijọ ti wọn n jẹri igbagbọ Protestant ni. Ni igba ti wọn ṣẹṣẹ n dide, awọn ijọ wọnyi duro gbọin fun Ọlọrun ati otitọ, ibukun Rẹ si wa pẹlu wọn. Ani awọn alaigbagbọ aye jẹri si ibukun ti o n tẹle gbigba awọn ikọni iyinrere. Ninu ọrọ woli naa si Israeli, “Okiki rẹ rekọja lọ si ọdọ awọn alaigbagbọ nitori ẹwa rẹ: nitori ti o peye latari ẹwa Mi, eyi ti mo dabo ọ, ni Oluwa wi.” Ṣugbọn wọn ṣubu nitori ifa ọkan kan naa ti o jẹ egun ati iparun fun Israeli—ifẹ lati tẹle apẹẹrẹ awọn alaiwabiọlọrun ati lati ba wọn dọrẹ. “Iwọ gbẹkẹle ẹwa rẹ, iwọ si ṣe panṣaga nitori okiki rẹ.” Isikiẹli 16:14, 15.

Ọpọ awọn ijọ Protestant n tẹle apẹẹrẹ aisedeede Romu nipa ibaṣepọ pẹlu “awọn ọba aye”—awọn ijọ ilu, nipasẹ ibaṣepọ wọn pẹlu ijọba, ati awọn ijọ miran nipa wiwa oju rere aye. “Babiloni” ti o tumọ si rudurudu ba awọn ẹgbẹ wọnyi mu, gbogbo wọn n sọ wipe wọn ri ikọni wọn lati inu Bibeli, sibẹ wọn pin yẹlẹyẹlẹ si orisirisi ẹgbẹ ti ko ṣe e kà, pẹlu awọn ikọni ati ironu ti wọn tako ara wọn.

Yatọ si ifọwọsowọpọ ti o jẹ ẹṣẹ pẹlu aye, awọn ijọ ti wọn yapa kuro lọdọ Romu si ni awọn iwa rẹ miran.

Iṣẹ Katoliki ti Romu kan sọ wipe “bi ijọ Romu ba fi igba kan ri jẹbi ibọrisa nitori awọn eniyan mimọ, ọmọbinrin rẹ, Ijọ England, jẹbi ẹṣẹ kan naa, ẹni ti o ya ile ijọsin mẹwa sọtọ si Maria fun ẹyọkan ti a ya sọtọ si Kristi.”

Dr Hopkins pẹlu, ninu “A Treatise on the Millenium” (Akọsilẹ lori Ẹgbẹrun Ọdun) sọ wipe: “Ko sí ìdí fun wa lati ro wipe Ijọ Romu nikan ni o ni ẹmi ati iṣesi ti o lodi si ẹsin Kristẹni. Awọn ijọ Protestant ni ọpọlọpọ aṣodisi-kristi ninu wọn, a ko si fọ wọn mọ rárá kuro ninu . . . iwa ibajẹ ati iwa buburu rẹ.”

Nipa bi Ijọ Presbyterian ti kuro ninu Romu, Dr Guthrie kọwe pe: “Ni ọgọrun ọdun mẹta seyin, ijọ wa, pẹlu Bibeli ti a ṣi silẹ lori asia rẹ, pẹlu ọrọ akọle yii, ‘Wá inu Iwe Mimọ’ lori iwe rẹ, jade kuro lati ẹnu ọna Romu.” Lẹyin eyi o bere ibeere ti o ṣe pataki yii: “Ṣe wọn jade kuro ninu Romu pẹlu ara mimọ bi?”

Spurgeon sọ wipe, “O dabi ẹnipe titẹle ami majẹmu ti jẹ Ijọ England ra; ṣugbọn o dabi ẹnipe aitẹriba-fun-ilana-ijọ kun fun ero aigbọran bakan naa. Awọn ti a n fi oju rere wo n yipada lẹyọ kọọkan kuro ninu agbekalẹ igbagbọ. Laiṣe aniani, mo gbagbọ wipe, ọkan England kun fun aigbọran gbogbo ti o tun ni igboya lati lọ si ori pẹpẹ iwaasu lati pe ara rẹ ni Kristẹni.”

Kini ipilẹṣẹ iyapa nla? Bawo ni ijọ ṣe kọkọ yipada kuro ninu iyinrere alailabawọn? Nipa titẹle iṣesi ẹsin ibọrisa ni, lati le mu ki awọn alaigbagbọ o gba ẹsin Kristẹni. Apostoli Pọlu sọ, ani ni igba aye rẹ, wipe “Ohun ijinlẹ ẹṣẹ ti n ṣiṣẹ ná.” 2 Tẹsalonika 2:7. Ni akoko awọn apostoli, ijọ wa ni mimọ. Ṣugbọn “nigba ti ọrundun keji n lọ si opin ọpọ ninu awọn ijọ ni wọn ni irisi tuntun; otitọ ti igba iṣaaju poora, laikọbiarasi, bi awọn ọmọlẹyin akọkọ ti n lọ si ibojì wọn, awọn ọmọ wọn, pẹlu awọn ti a jere sinu ijọ, . . . jade siwaju wọn si sọ wipe iṣẹ naa ti di tuntun.” Lati le jẹ ki awọn ọmọlẹyin o duro, a fa odiwọn giga ti igbagbọ Kristẹni wa silẹ, latari eyi, “agbara ẹsin ibọrisa ṣan wọ inu ijọ, o si ko aṣa, iṣesi, ati ère rẹ dani.” Bi ẹsin Kristẹni ti ri oju rere ati atilẹyin awọn alaṣẹ aye, ọpọlọpọ awọn eniyan ni wọn fi ẹnu lasan gba a; ṣugbọn nigba ti wọn fi oju jẹ Kristẹni, ọpọlọpọ wọn “ni wọn si jẹ abọrisa ninu iwa wọn, ni pataki julọ ti wọn n jọsin ère wọn ni idakọnkọ.”

Ṣe iru igbesẹ kan naa ko ti fẹrẹ fi ara rẹ han tan ninu gbogbo ijọ ti wọn pe ara wọn ni Protestant? Bi awọn oludasilẹ, awọn ti wọn ni ẹmi afọmọ tootọ, ti n kọjalọ, awọn ọmọ wọn a jade siwaju, wọn a si “sọ iṣẹ naa di tuntun.” Nipa siso mọ igbagbọ awọn baba wọn ni aironu ti wọn si kọ lati gba otitọ miran ni afikun si ohun ti wọn ri, awọn ọmọ awọn alatunṣe yapa jinna réré kuro ninu apẹẹrẹ irẹlẹ, isera ẹni, ati kikọ aye silẹ. Bayi ni “iṣotitọ akọkọ ti ṣe parẹ.” Agbara ifẹ aye ti o n ṣan wọ inu ijọ si ko “pẹlu rẹ, awọn aṣa, iṣesi, ati ère rẹ.”

O ṣe ni laanu bi ibarẹ aye eyi ti i ṣe “iṣọta si Ọlọrun” ti jinlẹ to lọna ti o banilẹru, eyi ti o wa wọpọ laarin awọn atẹle Kristi! Awọn ijọ ti

wọn lokiki ninu ẹsin Kristẹni ti yapa kuro ninu odiwọn irẹlẹ, isera-ẹni, iṣotitọ ati iwabiọlọrun ti inu Bibeli to! John Wesley, ni sisọ nipa lílo owó ni ọna ti ko tọ sọ pe: "Maṣe fi eyikeyi ninu ẹbun ti o ṣeyebiye nì ṣofo, nitori titẹ ifẹ oju lọrun lasan, nipa aṣọ olowo iyebiye, tabi ohun ọṣọ ti ko wulo. Maṣe fi ohunkohun ṣofo ninu rẹ nipa ṣiṣe ile rẹ lọṣọ ni ọna àrà; nipa awọn ohun èlò ile olowo iyebiye; nipa awọn aworan ati ohun olowo iyebiye ti a n gbekọ ile. . . . Maṣe ṣe ohunkohun lati tẹ igberaga aye lọrun, lati ri ifẹ tabi iyin eniyan. . . . 'Niwọn igba ti o ba ti n ṣe rere si ara rẹ, awọn eniyan yoo sọ nipa rẹ ni rere.' Niwọn igba ti o ba n 'wọ aṣọ ọgbọ wiwẹ,' ti o si n gbé ni 'pọpọ ṣinṣin lojoojumọ,' laiṣeyemeji ọpọ ni yoo sọ nipa bi o ti n fẹ ohun giga to, ati ilawọ ati igbanilalejo rẹ. Ṣugbọn maṣe ra isọrọ rere wọn bi o ti wu ki o dara to. Dipo eyi, jẹ ki iyì ti o wa lati ọdọ Ọlọrun o tẹ ọ lọrun." Ṣugbọn ninu ọpọ awọn ijọ loni, a ti kọ iru awọn ikọni wọnyi silẹ.

Fifi ẹnu jẹ ẹlẹsin ti di gbajugbaja ninu awọn ijọ loni. Awọn alaṣẹ, oloṣelu, agbẹjọro, onișegun, onișowo, darapọ mọ ijọ gẹgẹ bi ohun elo lati ri ibọwọfun ati ifọkantan ni awujọ, ati lati le tẹsiwaju ninu ifẹ aye wọn. Bayi ni wọn ṣe n fi awọn iwa aișododo wọn pamọ sabẹ Kristẹni afẹnujẹ. Ọpọ awọn ẹgbẹ ẹsin ti wọn ni agbara latari ọrọ ati orukọ awọn olufẹ aye ti wọn ṣe itẹbọmi yii, tun ṣe akitiyan si lati ni okiki ati iranlọwọ. Awọn ile ijọsin ti wọn tobi, ti a ṣe lọṣọ lọna ti o nani lowo julọ, ni a kọ si awọn adugbo ti wọn lokiki. Awọn olujọsin n ṣe ara wọn lọṣọ pẹlu aṣọ asiko to jẹ olowo iyebiye. Owo oșu gọbọi ni a n san fun awọn oniwaasu to ni ẹbun lati le dawọn lara ya ati lati le pe awọn eniyan wá. Awọn iwaasu rẹ ko gbọdọ fẹnu ba awọn ẹṣẹ ti wọn wọpọ, ṣugbọn o nilati ṣe jẹjẹ ki o si dun mọni leti. Bayi ni a ṣe ni awọn ẹlẹṣẹ ti wọn gbajumọ ninu iwe ijọ, ti a si fi awọn ẹṣẹ ti wọn gbajumọ pamọ si abẹ afarawe iwabiọlọrun.

Ni sisọ nipa iwuwasi awọn Kristẹni si aye ni akoko yii, iwe atẹjade kan ti ki i ṣe ti ẹsin sọ wipe: "Laimọ ijọ ti juwọ silẹ fun ẹmi akoko yii, o si ti jẹ ki ilana ijọsin rẹ o ba ifẹ asiko yii mu." "Ni tootọ, ohun gbogbo ti yoo mu ki ẹsin o joju ni gbese, ni ijọ n lo gẹgẹ bi ohun elo." Onkọwe kan ninu New York Independent sọ nipa ijọ Methodist bayi: "Ìlà ti o ya awọn oniwabiọlọrun ati awọn alailẹsin ti fẹrẹ parẹ tan, awọn onitara laarin awọn mejeeji n ṣe akitiyan lati mu gbogbo iyatọ ti o wa laarin iṣesi ati igbadun wọn kuro." "Bi ẹsin ba ti lokiki to dabi ẹnipe o n jẹ ki iye awọn ti wọn fẹ ri èrè rẹ laiṣe ojuṣe rẹ o pọ si ni."

Howard Crosby sọ wipe: "O jẹ ohun ti o kan ni gbọngbọn wipe ijọ Kristi ko mura to lati mu erongba Oluwa rẹ ṣẹ. Gẹgẹ bi awọn Ju igbaani ti ṣe jẹ ki ibaṣepọ wọn pẹlu awọn orilẹ ede abọriṣa o yi ọkan wọn kuro lọdọ Ọlọrun, . . . bẹẹ gẹgẹ ni ijọ Kristi ti n ṣe bayii, pẹlu ibaṣepọ rẹ eyi

ti ko tọna pẹlu aye alaigbagbọ ti o kọ ilana ọrun fun igbesi aye otitọ rẹ silẹ, o n jọwọ ara rẹ lọwọ fun awọn iwa buburu awujọ ti ko ni Kristi, o n sọ iru ọrọ kan naa, o si n ri awọn idahun ti wọn ṣajeji si ifihan Ọlọrun, ti wọn tako gbogbo idagbasoke ninu oore ọfẹ."

Ninu igbi ifẹ aye ati ifẹ faaji yii, isẹ-ara-ẹni ati ifi-ara-ẹni rubọ nitori Kristi ti fẹrẹ parun tan. "Diẹ lara awọn ọkunrin ati obinrin ti wọn n ṣiṣe ninu awọn ijọ ni a kọ nigba ti wọn wa ni ọmọde lati fi ara wọn rubo lati le fi ohun kan silẹ tabi ṣe ohun kan fun Kristi." Ṣugbọn "bi ko ba si owó, . . . a ko gbọdọ pe ẹnikẹni lati fi silẹ. Rara o! ẹ ṣe ajọdun, àpéwò, àṣè, tabi ohunkohun lati jẹ—ohunkohun lati da awọn eniyan lara ya."

Gomina Washburn ti Winsconsin ninu iṣẹ iranṣẹ ọdun rẹ, ni January 9, 1873 sọ bayi: "O dabi ẹnipe a nilo ofin diẹ lati tú awọn ile ẹkọ ti a ti n kọ awọn onitẹtẹ ká. Wọn wa ni ibi gbogbo. Ani ijọ paapa (boya laimọ) ni igba miran n ṣiṣẹ fun eṣu. Iré orin nibi ti a ti n funni ni ẹbun, ẹbun tẹtẹ, ni igba miran lati ran iṣẹ ẹsin tabi iṣẹ aanu lọwọ, ṣugbọn ni ọpọ igba fun awọn idi ti ko nitumọ pupọ, tẹtẹ, ifunni ni ẹbun, ati bẹẹbẹẹ lọ, jẹ ọna lati gba owo ti a ko ṣiṣẹ fun. Ko si ohun ti o bani niwajẹ tabi ti o n pani bi ọti, paapaa julọ fun awọn odo bi i níní owo tabi ohun ini laiṣiṣẹ. Awọn eniyan pataki ti wọn n kopa ninu iru tẹtẹ yii, wọn n pa ẹri ọkan wọn lẹnu mọ pẹlu ero wipe iṣẹ rere ni wọn maa fi owo naa ṣe, ko yanilẹnu wipe awọn ọdọ ipinlẹ yii saba maa n ṣubu sinu iwa ti ifẹ ere ti o lewu saba maa n fà."

Ẹmi ifẹ aye n wọnu awọn ijọ kaakiri ninu ẹsin Kristẹni. Robert Atkins ninu iwaasu ti o ṣe ni London, ṣe apejuwe ifasẹyin ẹmi ti o gbilẹ ni England: "Awọn ti wọn jẹ olododo lootọ n parẹ kuro ninu aye, ko si si ẹni ti o ro o ninu ọkan rẹ. Awọn ti wọn n pe ara wọn ni ẹlẹsin ni ode oni yii, ni gbogbo ijọ jẹ olufẹ aye, awọn ti n ṣe bi aye, olufẹ idẹra, ti wọn nifẹ si ibọwọfun eniyan. A pe wọn lati jiya pẹlu Kristi, ṣugbọn wọn sa fun itiju. . . . Ipẹyinda, ipẹyinda, ipẹyinda, ni a kọ siwaju gbogbo ile ijọsin; bi wọn ba ni imọlara rẹ ni, ireti i ba wa; ṣugbọn, o maṣe o! wọn n kigbe, 'A jẹ ọlọrọ, a si n pọ si ni ọrọ, a ko si nilo ohun kan.'"

Ẹsun ẹṣẹ nla ti a fi kan Babiloni ni pe o "mu gbogbo orilẹ ede mu ninu ọti waini ibinu agbere rẹ." Ago ipaniloti eyi ti o fun araye tumọ si ẹkọ eke ti o gba latari ibaṣepọ ti ko bojumu rẹ pẹlu awọn ẹni nla aye. Ibarẹ aye ti ba igbagbọ rẹ jẹ, ni ipa tirẹ, o ni ipa buburu lori aye nipa kikọ awọn ikọni ti wọn tako ọrọ kedere ti o wa ninu Iwe Mimọ.

Romu fi Bibeli pamọ kuro ni ọdọ awọn eniyan o si fẹ ki gbogbo eniyan o gba ikọni rẹ ropo. Iṣẹ Atunṣe ni lati dari awọn eniyan pada sinu ọrọ Ọlọrun; ṣugbọn nje ki i ṣe wipe ootọ ni wipe ninu awọn ijọ loni, a n kọ awọn eniyan lati gbe igbagbọ wọn si ori igbagbọ ati

ikọni ijọ wọn dipo si ori Iwe Mimọ? Charles Beecher sọ nipa awọn ijọ Protestant bayii: “Wọn kọ lati sọ ọrọ lile si awọn igbagbọ kan pẹlu iṣọra eyi ti awọn baba mimọ i ba fi kọ lati sọ ọrọ lile lati tako ijọsin awọn ẹni mimọ ati ajẹriku ti o ṣẹṣẹ n bẹrẹ eyi ti wọn fi n kọni. . . . Awọn ijọ oniwaasu Protestant ti so ọwọ ara wọn ati ti ẹnikeji papọ debi pe, laarin gbogbo wọn, eniyan ko le di oniwaasu rara, lai gba awọn iwe kan ni afikun si Bibeli. . . . Ki i ṣe ero lasan ni wipe agbara akọsilẹ igbagbọ ti bẹrẹ si nii ko Bibeli ni papa mọra bi Romu ti ṣe, bi o tilẹ jẹ wipe o n ṣẹlẹ ni bonkẹlẹ.”

Nigba ti awọn olukọ tootọ ba n ṣe alaye ọrọ Ọlọrun, awọn ọmọwe ati alufa ti wọn sọ wipe wọn ni oye Iwe Mimọ a dide, wọn a pe ẹkọ ti o yè kooro ni èké, bayi ni wọn a ṣe yi awọn ti n wa otitọ pada kuro ni ọna otitọ. Ti kii ba n ṣe wipe aye ti kun fun ọti waini Babiloni laisi ireti mọ, ọgọọrọ eniyan ni i ba gbagbọ ti wọn a si yipada nipasẹ otitọ ti o han kedere ninu ọrọ Ọlọrun. Ṣugbọn o dabi ẹnipe ọrọ ẹsin igbagbọ ko ye ara wọn mọ ti awọn eniyan ko si mọ ohun ti o yẹ ki wọn gbagbọ gẹgẹ bi otitọ. Ẹṣẹ aironupiwada araye wa ni ẹnu ọna ijọ.

Iṣẹ iranṣẹ angẹli keji ti Ifihan 14 ni a kọkọ waasu rẹ ni igba ẹrun 1844, nigba naa o ba awọn ijọ United States mu gan an ni, ni ibi ti a ti kede ikilọ nipa idajọ kaakiri julọ, ti a si ti fẹrẹ kọ ọ silẹ tan patapata, ati nibi ti ifasẹyin awọn ijọ ti ṣẹlẹ kankan. Ṣugbọn iṣẹ iranṣẹ angẹli keji ko wa si imuṣẹ tan ni 1844. Nigba naa, awọn ijọ ti ṣubu ninu iwa latari bi wọn ti kọ imọlẹ iṣẹ iranṣẹ ipadabọ silẹ; ṣugbọn wọn ko ṣubu tan patapata. Bi wọn ti n tẹsiwaju lati kọ awọn otitọ pataki fun akoko yii silẹ bẹẹ ni wọn tubọ n ṣubu si. Amọ a koi tii le sọ wipe “Babiloni ti ṣubu , . . . nitori o mu gbogbo orilẹ ede mu ninu ọti ibinu agbere rẹ.” Koi tii mu ki gbogbo orilẹ ede ṣe eyi. Ẹmi titẹle aye ati aikọbiarasi otitọ idanniwo fun akoko yii si wa, o si n gbilẹ si ninu awọn ijọ Protestant ni gbogbo orilẹ ede ti n ṣe ẹsin Kristẹni; awọn ijọ yii si wa ninu ibawi ẹlẹru ti angẹli keji. Ṣugbọn iṣẹ ifasẹyin koi tii pari.

Bibeli sọ wipe ṣaaju wiwa Oluwa, Satani yoo ṣiṣẹ “pẹlu gbogbo agbara ati ami eke iyanu, ati pẹlu gbogbo itanjẹ ti aiṣododo gbogbo;” ati awọn ti wọn “ko gba ifẹ fun otitọ ki wọn baa le di ẹni igbala” ni a yoo fi silẹ lati gba “itanjẹ ti o lagbara ki wọn baa le gba irọ gbọ.” 2 Tẹsalonika 2:9:11. O di igba ti wọn ba de ipo yii, ti ibaṣepọ ijọ pẹlu aye ba fẹsẹmulẹ daradara kaakiri ilẹ Kristẹni ki Babiloni to ṣubu patapata. Labalalabala ni iyipada yii n wa, imuṣẹ Ifihan 14:8 ni kikun si wa ni ọjọ iwaju.

Laika okunkun ẹmi ati iyapa kuro ni ọdọ Ọlọrun ti o wa ninu awọn ijọ ti wọn parapọ di Babiloni si, ẹgbẹ awọn atẹle Kristi ni tootọ si wa ninu wọn. Ọpọlọpọ wa ninu awọn wọnyi ti wọn koi tii ri otitọ pataki

fun akoko yii ri. Ki i ṣe diẹ ninu wọn ni ipo ti wọn wa bayi ko tẹ lọrun ti wọn si n fẹ imọlẹ si. Lasan ni wọn n wa aworan Kristi ninu awọn ijọ ti wọn n lọ. Bi awọn ẹgbẹ wọnyi ba ti n yapa jina réré kuro ni ọdọ otitọ, ti wọn si n dara pọ mọ aye si, iyatọ ti o wa laarin awọn ẹgbẹ mejeeji a tubọ farahan si, nikẹyin, yoo yọri si ipinya. Akoko n bọ nigba ti awọn ti wọn fẹran Ọlọrun ju ohunkohun lọ ko ni le ni ibaṣepọ mọ pẹlu awọn "olufẹ faaji ju olufẹ Ọlọrun lọ; ti wọn ni afarawe iwabiọlọrun, ṣugbọn ti wọn sẹ agbara rẹ."

Ifihan 18 tọka si akoko ti, nitori bi wọn ti kọ ikilọ mẹtẹẹta ti Ifihan 14:6—12 silẹ, ni kikun, ijọ yoo wa ni ipo tí angẹli keji sọ tẹlẹ, a yoo si pe awọn eniyan Ọlọrun ti wọn wa ni Babiloni lati jade kuro ninu rẹ. Iṣẹ iranṣẹ yii ni eyi ti o kẹyin ti a yoo fun araye; yoo si ṣe iṣẹ ti a fẹ ki o ṣe. Nigba ti a ba fi awọn ti "ko gba otitọ gbọ, ti wọn ni inu didun si aiṣododo" (2 Tẹsalonika 2:12) silẹ lati gba itanjẹ nla ati lati gba eke gbọ, nigba naa ni imọlẹ otitọ yoo tan si awọn ti ọkan wọn ṣi silẹ lati gba a, gbogbo awọn ọmọ Ọlọrun ti wọn wa ni Babiloni yoo si dahun si ìpè naa: "Ẹ jade kuro ninu rẹ, ẹyin eniyan Mi." Ifihan 18:1.

22

Awọn Asọtẹlẹ Wa Si Imuṣẹ

Nigba ti akoko ti a kọkọ reti wiwa Oluwa kọja,—ni igba òjò 1844—awọn ti wọn ti fi igbagbọ wọna fun ifarahan Rẹ kun fun iyemeji ati ainidaniloju fun igba diẹ. Nigba ti aye ri wọn gẹgẹ bi awọn ti a já kulẹ patapata ti a si sọ wipe wọn gba ẹtan gbọ, ọrọ Ọlọrun si ni orisun itunu wọn. Ọpọlọpọ ni wọn tẹsiwaju lati wa Iwe Mimọ, ti wọn n wa ẹri fun igbagbọ wọn ni akọtun ti wọn si n fi pẹlẹkutu kẹkọ isọtẹlẹ lati le ri imọlẹ si. Ẹri Bibeli ti o kin ipo wọn lẹyin fi ara han kedere. Awọn ami ti a ko le ṣe aṣiṣe wọn tọka si wipe wiwa Kristi ti sunmọ. Ibukun pataki Oluwa, ti ti iyipada awọn ẹlẹṣẹ ati ti isọji ẹmi ni aarin awọn Kristẹni jẹri si wipe iṣẹ iranṣẹ naa wa lati ọrun. Bi o tilẹ jẹ wipe awọn onigbagbọ ko le ṣe alaye ijakulẹ wọn, ọkan wọn balẹ wipe Ọlọrun ni o dari wọn ninu iriri wọn ni atẹyinwa.

Ikilọ ti a wé mọ asọtẹlẹ ti wọn ri wipe o ni i ṣe pẹlu akoko ipadabọ lẹẹkeji ni eyi ti ba ipo ainidaniloju ati iyemeji wọn mu, o si gba wọn niyanju lati duro pẹlu suuru ninu igbagbọ wipe ohun ti o ṣokunkun si iye wọn nisinsinyii yoo mọlẹ ni igba ti akoko ba to.

Lara awọn asọtẹlẹ wọnyi ni ti Habakuku 2:1—4: “Emi yoo duro, emi yoo si maa ṣọna, emi yoo duro si ori ile iṣọ, emi yoo si ṣọna lati ri ohun ti yoo sọ fun mi ati èsi ti yoo fọ nigba ti a bá ba mi wi. Oluwa si dami lohun wipe, kọ iran naa silẹ, ki o si han kedere lori tabili, ki ẹni ti o ka a baa le sare pẹlu rẹ. Nitori ti iran naa wa fun akoko ti a yan, ṣugbọn ni opin yoo sọrọ, ki yoo si ṣèké: bi o tilẹ pẹ, duro dè é; nitori ti yoo wa dandan, ki yoo si pẹ. Kiyesi, ọkan rẹ ti o gbega soke ko ṣe deede ninu rẹ: ṣugbọn olododo yoo wa nipa igbagbọ rẹ.”

Lati 1842 aṣẹ ti a pa ninu isọtẹlẹ yii lati "kọ iran naa silẹ, ki o si han kedere lori tabili, ki ẹni ti o ka a baa le sare pẹlu rẹ," ti ta Charles Fitch lọyẹ lati ya aworan isọtẹlẹ, lati ṣe alaye awọn iran Danieli ati Ifihan. Itẹjade aworan yii ni a ri gẹgẹ bi imuṣẹ aṣẹ ti Habakuku pa. Ko si ẹni ti o kiyesi nigba naa wipe a sọ ninu asọtẹlẹ kan naa nipa ifasẹyin—akoko iduro—ninu imuṣẹ iran naa. Lẹyin ijakulẹ naa, ẹsẹ iwe mimọ yii wa ṣe pataki jọjọ: "Iran naa wa fun akoko kan, ṣugbọn nikẹyin, yoo sọrọ, ki yoo si ṣèké: bi o tilẹ pẹ, duro de e; nitori ti yoo wa dandan, ki yoo pẹ. . . . Olododo yoo wa nipa igbagbọ rẹ."

Abala kan ninu isọtẹlẹ Isikiẹli tun jẹ orisun okun ati itunu fun awọn onigbagbọ: "Ọrọ Oluwa wa si ọdọ mi, o n wipe, Ọmọ eniyan, iru owe wo ni ẹ n pa ni ile Israeli, wipe, A fa awọn ọjọ naa seyin, gbogbo iran si n baku? Nitori naa, sọ fun wọn, Bayi ni Oluwa Ọlọrun wi. . . . Awọn ọjọ naa sunmọ etile, ti gbogbo iran yoo wa si imuṣẹ. . . . Emi yoo sọrọ, ọrọ ti Emi yoo sọ yoo si wa si imuṣẹ; a ki yoo fa a seyin mọ." "Awọn ara ile Israeli sọ wipe, Iran ti o ri wa fun ọjọ pipẹ, o si n sọ tẹlẹ nipa akoko ti o jinna réré. Nitori naa sọ fun wọn, Bayii ni Oluwa Ọlọrun wi; A ki yoo fa awọn ọrọ Mi gun mọ, ṣugbọn ọrọ ti Mo ti sọ yoo wa si imuṣẹ." Isikiẹli 12:21—25, 27, 28.

Inu awọn ti wọn n duro dun, wọn ni igbagbọ wipe Ẹni ti o mọ opin lati ibẹrẹ ti woye, O si ti ri ijakulẹ wọn, O si ti fun wọn ni igboya ati ireti. Ti kii ba n ṣe abala Iwe Mimọ iru eyi, ti o gba wọn niyanju lati duro pẹlu suuru ki wọn si duro ṣinṣin ninu igbẹkẹle wọn ninu ọrọ Ọlọrun, igbagbọ wọn i ba baku ninu akoko idanwo yii.

Owe wundia mẹwa ti Matiu 25 tun ṣe alaye iriri awọn Onireti. Ninu Matiu 24, ni idahun si ibeere awọn ọmọ ẹyin Rẹ nipa awọn ami wiwa Rẹ ati ti opin aye, Kristi tọka si diẹ ninu awọn iṣẹlẹ ti wọn ṣe pataki julọ ninu itan aye ati ti ijọ lati akoko wiwa Rẹ ni akọkọ titi fi di akoko wiwa Rẹ lẹẹkeji, eyi ni, pipa Jerusalẹmu run, ipọnju nla ti ijọ labẹ inunibini awọn abọrisa ati ijọ padi, oorun ti o ṣokunkun ati osupa ti o di ẹjẹ, ati jijabọ awọn irawọ. Lẹyin eyi, O sọ nipa wiwa Rẹ ninu ijọba Rẹ, O si pa owe ti o ṣe alaye awọn ẹgbẹ meji ti wọn n wọna fun ifarahan Rẹ. Ori 25 bẹrẹ pẹlu ọrọ: "Nigba naa ni ijọba ọrun yoo dabi awọn wundia mẹwa." Nibi ni a ti sọ nipa ijọ ti yoo wa ni akoko ikẹyin, eyi kan naa ti a ṣe afihan rẹ ni opin ori kẹrinlelogun. Ninu owe yii, iriri wọn ni a ṣe apejuwe rẹ pẹlu awọn iṣẹlẹ inu aṣa igbeyawo ni iha ila oorun.

"Nigba naa ni ijọba ọrun yoo dabi wundia mẹwa, ti wọn gbe fitila wọn, ti wọn si jade lati lọ pade ọkọ iyawo. Marun ninu wọn jẹ ọlọgbọn, marun ninu wọn jẹ omugọ. Awọn ti wọn jẹ omugọ gbe fitila wọn, ṣugbọn wọn ko mu epo dani pẹlu wọn, ṣugbọn awọn ti wọn jẹ

ọlọgbọn mu epo dani ninu kolobo pẹlu fitila wọn. Nigba ti ọkọ iyawo pẹ de, gbogbo wọn toogbe wọn si sun. Ni oruganjọ, ariwo ta, Kiyesi ọkọ iyawo n bọ; ẹ jade lọ pade rẹ."

Wiwa Kristi, bi iṣẹ iranṣẹ angẹli akọkọ ti kede rẹ ni a ri gẹgẹ bi eyi ti o duro fun wiwa ọkọ iyawo. Iṣẹ atunṣe ti o wọpọ labẹ ikede wiwa Rẹ laipẹ, duro fun bi awọn wundia ti jade lọ. Gẹgẹ bi i ti Matiu ori kẹrindinlogun, awọn ẹgbẹ meji ni a ṣe afihan wọn ninu owe yii. Gbogbo wọn ni wọn mu fitila wọn lọwọ, Bibeli pẹlu imọlẹ rẹ, wọn jade lọ lati pade Ọkọ iyawo. Ṣugbọn nigba ti "awọn ti wọn jẹ omugọ mu fitila wọn, wọn ko gbe epo dani pẹlu wọn," "awọn ọlọgbọn gbe epo dani ninu kolobo wọn pẹlu fitila wọn." Awọn ẹgbẹ ti o kẹyin gba oore ọfẹ Ọlọrun, agbara Ẹmi Mimọ ti n yinilọkan pada to si n lanilọyẹ, eyi ti o jẹ ki ọrọ Rẹ o jẹ fitila si ẹsẹ ati imọlẹ si ọna. Ninu ibẹru Ọlọrun wọn kọ ẹkọ Iwe Mimo lati kọ nipa otitọ, wọn si fi tọkantọkan wa ọkan ati igbesi aye mimọ. Awọn wọnyi ni iriri lẹnikọọkan, igbagbọ ninu Ọlọrun ati ninu ọrọ Rẹ, eyi ti ijakulẹ tabi ifaseyin ko le bi ṣubu. Awọn miran "gbe fitila wọn, wọn ko si mu epo dani pẹlu wọn." Wọn gbe igbesẹ latari igbonara. Iṣẹ iranṣẹ ẹlẹru naa ru ibẹru wọn soke, ṣugbọn wọn gbẹkẹle igbagbọ awọn arakunrin wọn, ina kekere ti inu didun mu wa tẹ wọn lọrun laisi oye otitọ ti o ye kooro tabi iṣẹ oore ọfẹ ti o munadoko ninu ọkan. Awọn wọnyi jade lati lọ pade Oluwa, wọn kun fun ireti nitori ere ti yoo wa kankan; ṣugbọn wọn ko mura silẹ fun ifaseyin ati ijakulẹ. Nigba ti idanwo de, igbagbọ wọn baku, ina wọn si jo ajoreyin.

"Nigba ti ọkọ iyawo pẹ de, gbogbo wọn toogbe wọn si sun." Pipẹ ti ọkọ iyawo pẹ duro fun akoko ti o kọja nigba ti wọn n reti Oluwa, ijakulẹ naa ati eyi ti o dabi ifaseyin. Ni akoko ainidaniloju yii, ifẹ awọn ọlọkan meji, ti wọn fi oju gbagbọ bere si nii tutu, akitiyan wọn n rẹwẹsi; ṣugbọn awọn ti igbagbọ wọn duro lori imọ ti wọn ri ninu Bibeli ní apata ni abẹ ẹsẹ wọn, ti igbi ijakulẹ ko le ṣan danu. "Gbogbo wọn toogbe, wọn si sun;" ẹgbẹ kan wa ni aibikita wọn si kọ igbagbọ wọn silẹ, ẹgbẹ keji duro pẹlu suuru wọn n wọna boya a yoo fun wọn ni imọlẹ ti o han kedere miran. Sibẹ ninu aṣalẹ idanwo, o dabi ẹnipe awọn ẹgbẹ ti o kẹyin, padanu itara ati ifọkansin wọn diẹ. Awọn onilowọwọ ọkan ti wọn gba ẹsin lerefe ko le rọgbọku le ori igbagbọ awọn arakunrin wọn mọ. Olukuluku ni yoo duro fun ara rẹ.

Laarin akoko yii, irokuro ẹsin bẹrẹ si nii dide. Awọn kan ti wọn sọ wipe wọn jẹ onigbagbọ pẹlu itara ninu iṣẹ iranṣẹ naa kọ ọrọ Ọlọrun silẹ gẹgẹ bi atọna ti ko le baku, wọn n sọ wipe Ẹmi ni o n dari wọn, wọn jọwọ ara wọn silẹ fun èrò, àbá ati imọlara ọkan wọn lati dari wọn. Awọn kan wa ti wọn fi igbonara alaimọkan han, wọn n ba gbogbo ẹni

ti ko fi ọwọ si iwa wọn wi. Awọn ẹgbẹ Onireti ko fi oju rere wo igbagbọ agbasodi wọn; sibẹ wọn ṣiṣẹ lati mu abuku ba iṣẹ otitọ.

Satani n wa ọna nipasẹ eleyi lati tako iṣẹ Ọlọrun, ki o si pa a run. Ẹgbẹ ti n waasu ipadabọ ru ifẹ awọn eniyan soke, ọgọọrọ awọn ẹlẹṣẹ ni wọn yipada, awọn olootọ si n fi ara wọn silẹ fun iṣẹ kikede otitọ, ani ni akoko iduro. Ọmọ alade iwa buburu n padanu awọn ọmọ ijọba rẹ; lati le mu abuku ba iṣẹ Ọlọrun, o wa lati tan awọn ti wọn gba igbagbọ naa jẹ, ki o si jẹ ki wọn gba a sodi. Awọn aṣoju rẹ si ti ṣetan lati tọka si gbogbo eke, gbogbo aṣiṣe, gbogbo iwa ti ko bojumu, ki wọn fi han awọn eniyan pẹlu asọdun ti o lagbara lati le jẹ ki awọn Onireti ati igbagbọ wọn o di ohun irira. Pẹlu eleyi, iye awọn ti o ba le ko wa lati jẹ ki wọn gba igbagbọ ipadabọ lẹẹkeji, nigba ti o si n dari ọkan wọn, bẹẹ gẹgẹ ni anfani rẹ a ṣe pọ to lati tọka awọn eniyan si wọn gẹgẹ bi aṣoju gbogbo awọn onigbagbọ.

Satani ni “olufisun awọn ara,” ẹmi rẹ si ni o n dari awọn eniyan lati maa wa aṣiṣe ati ibaku awọn eniyan Ọlọrun, ki o si mu wọn wa si gbangba, nigba ti a ko ni mẹnuba iwa rere wọn. O maa n ṣiṣẹ nigba ti Ọlọrun ba n ṣiṣẹ fun igbala ọkan. Nigba ti awọn ọmọ Ọlọrun wa fi ara wọn han niwaju Oluwa, Satani pẹlu wa laarin wọn. Ninu gbogbo isọji o ṣetan lati mu awọn ti a ko ya ọkan wọn si mimọ ti oye wọn ko kun to wọle. Nigba ti awọn wọnyi ba gba awọn otitọ diẹ, ti wọn si ni ipo laarin awọn onigbagbọ, a ṣiṣẹ nipasẹ wọn lati mu awọn ikọni ti yoo tan awọn alaibikita jẹ wa. A ko le pe ẹnikẹni ni Kristẹni nitori pe a ri papọ mọ awọn ọmọ Ọlọrun, tabi ninu ile ijọsin tabi nibi tabili Oluwa. Satani saba maa n wa nibi awọn eto ọlọwọ julọ ni aworan awọn ti o le lo gẹgẹ bi aṣoju rẹ.

Ọmọ alade iwa buburu n jijakadi lori gbogbo ilẹ nibi ti awọn eniyan Ọlọrun ti n tẹsiwaju ninu irin ajo wọn lọ si ilu ọrun. Ninu gbogbo itan ijọ, ko si iṣẹ atunṣe kan ti o waye laisi idena nla kan. Bayii ni o se ri ni akoko Pọlu. Nibikibi ti awọn apostoli ba ti gbe ijọ kan dide, awọn kan a wa ti wọn a sọ wipe wọn gba igbagbọ naa, ṣugbọn ti wọn a mu ẹkọ odi wa, eyi ti o jẹ wipe bi wọn ba gba a, yoo le ifẹ fun otitọ jade nikẹyin ni. Luther pẹlu ri idamu ati iporuuru ọkan latari iṣẹ awọn onigbonara ẹsin ti wọn n sọ wipe Ọlọrun ni o n gba ẹnu wọn sọrọ, ti wọn si n gbe ero ati igbagbọ wọn ga ju ẹri Iwe Mimọ lọ. Ọpọlọpọ ti wọn ko ni igbagbọ ati iriri, ṣugbọn ti wọn kun fun ẹmi mo tó tán, ti wọn si fẹran lati maa gba ati lati maa sọ awọn ohun tuntun, ni afarawe otitọ awọn olukọ tuntun wọnyi saba maa n tanjẹ, wọn a si darapọ mọ awọn aṣoju Satani lati bi iṣẹ ti Ọlọrun mi si Luther lati gbé dide lulẹ. Awọn Wesley pẹlu ati awọn miran ti wọn bukun araye nipasẹ ipa ati igbagbọ wọn, ni wọn pade ète Satani ni

gbogbo ọna ni bi o ti n ti awọn onigbonara ju, alaimoye, ati awọn ti ọkan wọn ko yipada sinu irokuro ẹsin ni gbogbo ifarahan rẹ.

William Miller ko fi oju rere wo awọn ipa ti wọn n yọri si irokuro ẹsin. O sọ ni ibamu pẹlu Luther pe, gbogbo ẹmi ni a nilati fi ọrọ Ọlọrun dan wo. Miller sọ wipe, “Eṣu ni agbara nla lori iye awọn kan ni akoko yii. Ati bawo ni a o ṣe mo iru ẹmi ti wọn jẹ? Bibeli dahun: ‘Nipa eso wọn ni a o fi mọ wọn.’ . . . Ọpọ ẹmi ni wọn ti jade lọ sinu aye; a si ti pawá laṣẹ lati dan awọn ẹmi wo. Ẹmi ti ko ni jẹ ki a gbe ni ifarabalẹ, pẹlu ododo, ati pẹlu iwabiọlọrun, ninu aye ni akoko yii kii ṣe Ẹmi Kristi. O damiloju kedere wipe Satani nipa ti o ga ninu awọn ẹgbẹ alariwo yii. . . . Ọpọlọpọ ni aarin wa ti wọn n ṣe bi ẹnipe a ti ya wọn si mimọ patapata, ni wọn n tẹle ikọni eniyan, ti o si han kedere wipe wọn ko ni imọ otitọ gẹgẹ bi awọn ti wọn ko sọ wipe wọn ni.” “Ẹmi aṣiṣe a dari wa kuro ninu otitọ; Ẹmi Ọlorun a si dari wa sinu otitọ. Ṣugbọn, ẹyin sọ wipe, eniyan le wa ninu aṣiṣe ki o si ro wipe oun ni otitọ. Ki wa ni? A dahun, Ẹmi ati ọrọ naa fi imọ ṣọkan. Bi eniyan ba fi ọrọ Ọlọrun da ara rẹ lẹjọ, ti o si ri irẹpọ ti o peye ninu ọrọ Ọlọrun, o nilati gbagbọ wipe oun ni otitọ; ṣugbọn bi o ba ri wipe ẹmi ti o n dari oun ko si ni ibamu pẹlu gbogbo ofin tabi Iwe Ọlọrun, ki o ṣọra, ki o ma baa bọ sinu pakute eṣu.” “Mo saba maa n ri ẹri ifọkansin lati inú ọkàn wá ninu oju ti o mọlẹ, agbọn ti o tutu, ati ọrọ ti ko jade gaara ju lati inu gbogbo ariwo inu ẹsin Kristẹni lọ.”

Ni awọn akoko iṣẹ Atunṣe awọn ọta rẹ fi ẹsun gbogbo iwa buburu igbonara ẹsin kan awọn gan ti wọn n ṣiṣẹ lati dena rẹ. Ohun kan naa ni awọn alatako ẹgbẹ ipadabọ ṣe. Nigba ti ṣiṣe afihan ni ọna ti ko tọ, ati sisọ aṣiṣe awọn ti wọn gba ẹsin sodi ati awọn alara gbigbona ẹsin pẹlu asọdun kò tó, wọn tun n sọ ohun ti ko fi ara jọ otitọ rara. Ẹtanu ati ikorira ni o mu ki wọn ṣe eyi. Ikede wipe Kristi wa lẹnu ilẹkun damu alaafia wọn. Wọn bẹru wipe o le jẹ otitọ wọn si n reti wipe ki o ma jẹ otitọ, eyi ni aṣiri ijakadi pẹlu awọn Onireti ati igbagbọ wọn.

Nitori pe awọn elerokero nipa esin diẹ kan ri aaye wọ ẹgbẹ awọn Onireti ko ni ki a sọ wipe ẹgbẹ naa kii ṣe ti Ọlọrun, gẹgẹ bi a ko ti le sọ wipe nitori pe awọn ẹlẹtan wa ninu ijọ ni akoko Pọlu ati Luther, nitori naa, a yoo da iṣẹ wọn lẹbi. Ẹ jẹ ki awọn eniyan Ọlọrun o ji dide kuro ninu orun wọn ki wọn si bẹrẹ iṣẹ ironupiwada ati atunṣe lakọtun; ẹ jẹ ki wọn wá inu Iwe Mimọ lati le kọ nipa otitọ gẹgẹ bi o ti wa ninu Kristi, ẹ jẹ ki wọn fi ara wọn jin fun Ọlọrun patapata, a ki yoo si ṣe iyemeji wipe Satani n ṣiṣẹ, o si n ṣọna. Pẹlu gbogbo itanjẹ ti o le ṣe, yoo fi agbara rẹ han, yoo si pe gbogbo awọn angẹli ti wọn ti ṣubu ninu agbegbe rẹ lati ran an lọwọ.

Ki i ṣe iwaasu ipadabọ lẹẹkeji ni o fa irokuro nipa ẹsin ati iyapa. Awọn nnkan wọnyi bẹrẹ ni igba ẹrun 1844, nigba ti awọn onireti wa ni ipo iyemeji ati iporuuru ọkan nipa ipo ti wọn wà gan. Iwaasu iṣẹ iranṣẹ angẹli akọkọ ati ti "ìkede ni oru" ṣiṣẹ ni pato lati pana igbonara ẹsin ati iyapa. Awọn ti wọn kopa ninu ẹgbẹ ọlọwọ yii wa ni irẹpọ; ọkan wọn kun fun ifẹ fun ara wọn ati fun Jesu, Ẹni ti wọn n reti lati ri laipẹ. Igbagbọ kan, ireti onibukun kan, gbe ọkan wọn soke kọja agbara ipa eniyan kankan, o si jẹ aabo fun igbejako Satani.

"Nigba ti ọkọ iyawo pẹ de, gbogbo wọn toogbe wọn si sun. Ni oruganjọ, ariwo ta, kiyesi ọkọ iyawo n bọ; ẹ jade lọ pade rẹ. Nigba naa ni gbogbo awọn wundia dide wọn si tun fitila wọn ṣe." Matiu 25:5—7. Ni igba ẹrun ni 1844, laarin igba ti a kọkọ ro wipe 2300 ọjọ yoo pari ati asiko ikore ọdun kan naa, eyi ti a ri wipe o si gun siwaju, a kede iṣẹ iranṣẹ naa pẹlu ọrọ Iwe Mimọ gan: "Kiyesi, Ọkọ iyawo n bọ!"

Ohun ti o mú ẹgbẹ yii wá ni awari wipe aṣẹ Artaxerxes lati tun Jerusalẹmu kọ, ti o jẹ ibẹrẹ akoko 2300 ọjọ, bẹrẹ ni igba ikore 457 B. C., ki i si i ṣe ibẹrẹ ọdun naa, gẹgẹ bi wọn ti gbagbọ tẹlẹ. Bi a ba ka a lati igba ikore 457, 2300 ọdun yoo pari ni igba ikore 1844.

Awọn koko ọrọ ti a mu jade lati ara apẹẹrẹ inu Majẹmu Laelae tun tọka si akoko ikore gẹgẹ bi akoko ti iṣẹlẹ ti a fi "ṣiṣe iwẹnumọ ibi mimọ" ṣe apejuwe yoo ṣẹlẹ. Eyi yeni yekeyeke nigba ti a fiyesi ọna ti awọn apẹẹrẹ ti wọn sọ nipa wiwa Kristi ni akọkọ ti ṣe wa si imuṣẹ.

Pipa ọdọ aguntan ajọ irekọja jẹ apẹẹrẹ iku Kristi. Pọlu sọ wipe: "A ti fi Kristi Ajọ Irekọja wa rubọ fun wa." 1 Kọrintin 5:7. Ìtì eso akọso, eyi ti a n fi niwaju Oluwa ni akoko ajọ irekọja tọka si ajinde Kristi. Pọlu, nigba ti o n sọrọ nipa ajinde Oluwa ati gbogbo awọn eniyan Rẹ sọ wipe: "Kristi akọso eso; lẹyin eyi, awọn ti i ṣe ti Kristi ni igba wiwa Rẹ." 1 Kọrintin 15:23. Gẹgẹ bi ìtì tí a n fi, eyi ti i ṣe eso akọkọ ti o pọn ti a ko jọ ṣaaju ikore, Kristi jẹ akọso eso ikore ayeraye fun awọn ti a rapada ti a yoo kojọ sinu ọgba Ọlọrun ni akoko ajinde ni ọjọ iwaju.

Awọn apejuwe yii wa si imuṣẹ, ki i ṣe ni ibamu pẹlu iṣẹlẹ nikan, ṣugbọn ni ibamu pẹlu akoko pẹlu. Ni ọjọ kẹrinla ti oṣu akọkọ awọn Ju, ni ọjọ ati oṣu naa gan eyi ti, fun ẹdẹgbẹjọ (1500) ọdun seyin a pa ọdọ aguntan irekọja, Kristi, lẹyin ti o jẹ irekọja pẹlu awọn ọmọ ẹyin Rẹ, fi ajọ naa lelẹ eyi ti yoo jẹ ohun iranti iku Rẹ gẹgẹ bi "Ọdọ Aguntan Ọlọrun, Ẹni ti yoo ko ẹṣẹ araye lọ." Ni aṣalẹ ọjọ kan naa awọn ìkà eniyan mu lati kan An mọ agbelebu ati lati pa. Gẹgẹ bi imuṣẹ ìtì tí a fì, a jí Oluwa dide kuro ninu ipo oku ni ọjọ kẹta, "akọso awọn ti o sun," apẹẹrẹ gbogbo awọn olododo ti yoo jinde, awọn ti a yoo yi "ara buburu" wọn pada "lati dabi ara ologo Rẹ." Ẹsẹ 20; Filipi 3:21.

Ni ọna kan naa awọn apẹẹrẹ ti wọn sọ nipa ipadabọ yoo wa si imuṣẹ ni akoko ti isin alapẹrẹ tọka si. Labẹ eto Mose ṣiṣe iwẹnumọ fun ibi mimọ, tabi Ọjọ Iwẹnumọ, maa n bọ si ọjọ kẹwa oṣu keje awọn Ju (Lefitiku 16:29—31), nigba ti olu alufa, lẹyin ti o ba ti ṣe iwẹnumọ fun gbogbo Israeli, ti o si ti mu ẹṣẹ wọn kuro ninu ibi mimọ, yoo jade lati wa bukun fun awọn eniyan naa. Bẹẹ gẹgẹ ni a ṣe gbagbọ wipe Kristi, Olu Alufa wa nla, yoo fi ara han lati fọ aye mọ nipa pipa ẹṣẹ ati awọn ẹlẹṣẹ run, ati lati bukun awọn eniyan Rẹ ti n duro de E pẹlu aiku. Ọjọ kẹwa oṣu keje, Ọjọ Iwẹnumọ, akoko lati ṣe iwẹnumọ ibi mimọ, eyi ti o bọ si ọjọ kejilelogun oṣu kẹwa ni ọdun 1844, ni a ka si akoko wiwa Oluwa. Eyi wa ni ibamu pẹlu alaye ti a ti ṣe tẹlẹ wipe 2300 ọjọ yoo pari ni akoko ikore, a ko sì ríwí si ọrọ yii.

Ninu owe Matiu 25, akoko diduro ati titoogbe ṣaaju dide ọkọ iyawo. Eyi wa ni ibamu pẹlu koko ọrọ ti a ṣẹṣẹ ṣalaye tan, lati inu asọtẹlẹ ati lati inu awọn apẹẹrẹ. Wọn jẹ ootọ pọnbele; ọgọọrọ awọn onigbagbọ ni wọn kede "igbe ọganjọ oru."

Bi igbi okun, ẹgbẹ yii bo gbogbo ilẹ. Lati ilu de ilu, lati abule de abule, ati titi de awọn ileto ti wọn farasin, o jade lọ titi ti awọn eniyan Ọlọrun ti n duro fi ji dide patapata. Irokuro ẹsin poora niwaju ikede yii bi yinyin ti n parẹ niwaju oorun. Awọn onigbagbọ ri wipe iyemeji ati iporuuru ọkan wọn kuro, ireti ati igboya fun ọkan wọn lokun. Iṣẹ naa ko ni aṣeju ninu eyi ti o saba maa n ṣẹlẹ nigba ti ẹmi eniyan ba ru soke laisi idari ọrọ ati Ẹmi Ọlọrun. O dabi akoko irẹsilẹ ati ipada sọdọ Oluwa laarin awọn ọmọ Israeli lẹyin ti wọn ba ti gba iṣẹ iranṣẹ ibawi lati ẹnu awọn iranṣẹ Rẹ. O ni aami ti o maa n wà lara iṣẹ Ọlọrun ni akoko gbogbo. Ariwo ayo kọ wọpọ, ṣugbọn awọn eniyan n yẹ ọkan wọn wo, wọn n jẹwọ ẹṣẹ, wọn si n kọ aye silẹ. Imurasilẹ lati pade Oluwa ni o gba ẹmi wọn kan. Wọn tẹsiwaju ninu adura wọn si fi ara wọn jin fun Ọlọrun patapata.

Nigba ti o n ṣe alaye iṣẹ naa, Miller sọ wipe: "Ko si fifi ayọ han lọna nla: a pa iyẹn mọ di ọjọ iwaju, nigba ti ọrun ati aye yoo yọ papọ pẹlu ayọ ti ko ṣe e fẹnu sọ ti o kun fun ogo. Ko si ariwo: Iyẹn naa, a pa mọ fun ariwo lati ọrun. Awọn akọrin dakẹ: wọn n duro lati darapọ mọ ẹgbẹ awọn angẹli, ẹgbẹ akọrin lati ọrun. . . . Ko si idarudapọ irusoke ẹmi: gbogbo wọn wa pẹlu ọkan kan ati iye kan."

Ẹlomiran ti o kopa ninu ẹgbẹ yii jẹri wipe: "O fa yiyẹ ọkan wò ati rirẹ ọkan silẹ niwaju Ọlọrun ọrun ni ibi gbogbo. O mu ki ifẹ ọkan wọn o kuro ninu ohun aye, iwosan ija ati ibinu, ijẹwọ ẹṣẹ ati irẹra ẹni silẹ niwaju Ọlọrun, ati adura ikaanu fun ẹṣẹ ati irobinujẹ ọkan si I fun idariji ẹṣẹ ati oju rere. O fa irẹra-ẹni-silẹ ati irẹ-ọkan-silẹ eyi ti a koi tii riri. Bi Ọlọrun ti paṣẹ nipasẹ Joeli, nigba ti ọjọ nla Ọlọrun ba sunmọ

etile, o mu ki eniyan o fa ọkan rẹ ya ki i si i ṣe aṣọ ati yíyí sí Ọlọrun pẹlu awẹ ati ẹkun ati ọfọ. Bi Ọlọrun ti sọ nipasẹ Sekaraya, a tu ẹmi oore ọfẹ ati ipẹ si ori awọn ọmọ Rẹ; wọn wo O, Ẹni ti a gun ni ọkọ, ọfọ nla ṣẹlẹ ni ilẹ naa . . . awọn ti n wọna fun Ọlọrun pọn ọkan wọn loju niwaju Rẹ.”

Ninu gbogbo awọn ẹgbẹ ẹsin lati akoko awọn apostoli, ko si eyi ti o dabi ti igba ikore 1844 nitori pe ko ni ibaku eniyan ati itanjẹ Satani bii ti awọn iyoku. Ani lẹyin ọpọlọpọ ọdun, gbogbo awọn ti wọn kopa ninu ẹgbẹ yii, ti wọn duro gbọin lori ipele otitọ si ni imọlara agbara mimọ iṣẹ alabukun naa, wọn si jẹri si wipe lati ọdọ Ọlọrun ni o ti wa.

Pẹlu ipe, “Ọkọ iyawo n bọ; ẹ jade lọ pade Rẹ,” awọn ti wọn n duro “dide wọn si tun fitila wọn ṣe;” wọn kọ ẹkọ ọrọ Ọlọrun pẹlu ifẹ ti o ju ti tẹlẹ lọ. A ran awọn angẹli lati ọrun lati ta awọn ti n rẹwẹsi ji ati lati pese wọn silẹ lati gba iṣẹ iranṣẹ naa. Iṣẹ naa ko duro ninu ogbọn ati ẹkọ eniyan, bikoṣe ninu agbara Ọlọrun. Kii ṣe awọn ti wọn ni ẹbun julọ, bikoṣe awọn onirẹlẹ ati onifọkansin ni wọn kọkọ gbọ ti wọn si ṣe igbọran si ipe naa. Awọn agbẹ fi ohun ọgbin wọn silẹ ninu oko, awọn onisẹ ọwọ fi irin iṣẹ wọn silẹ, pẹlu omije, wọn fi ayọ jade lọ lati lọ ṣe ikilọ naa. Lapapọ, awọn ijọ kọ eti ọgbọin si iṣẹ iranṣẹ yii, iye awọn ti wọn gba iṣẹ iranṣẹ naa si jade kuro ninu wọn. Ninu iṣọwọṣiṣẹ Ọlọrun ikede yii wà ni iṣọkan pẹlu iṣẹ iranṣẹ angẹli keji o si fun iṣẹ naa lagbara.

Iṣẹ iranṣẹ wipe, “Wo o Ọkọ iyawo n bọ!” ko la ariyanjiyan pupọ lọ, bi o tilẹ jẹ wipe ẹri Iwe Mimọ yeni yekeyeke ti o tun han kedere. Agbara ti o n mi ni lọkan jade pẹlu rẹ. Ko si iyemeji, ko si ariyanjiyan. Nigba ti Kristi gun kẹtẹkẹtẹ wọ Jerusalẹmu awọn ti wọn pejọ lati gbogbo ilẹ naa lati ṣe ajọyọ wọ lọ si oke Olifi, bi wọn ti darapọ mọ awọn ero ti wọn n tẹle Jesu, wọn ni imisi akoko naa, wọn si kigbe wipe: “Ibukun ni fun Ẹni ti n bọ wa ni oruko Oluwa!” Matiu 21:9. Ni ọna kan naa ni awọn alaigbagbọ ti wọn rọ wa si ipade awọn onireti—diẹ wa lati le mọ ohun ti wọn n ṣe, awọn miran wa lati le fi wọn ṣe ẹlẹya—ni imọlara agbara ti o wa pẹlu iṣẹ iranṣẹ naa: “Wo o Ọkọ iyawo n bọ wa.”

Ni akoko naa igbagbọ ti o n mu adura gba wa—igbagbọ ti o bọwọ fun bi a ti n fi èrè funni. Gẹgẹ bi ojo lori ilẹ gbigbẹ, Ẹmi oore ọfẹ bọ si ori awọn ti n fi tọkantọkan wa a. Awọn ti wọn n reti lati duro lojukoju pẹlu Olurapada wọn ni ayọ ti ko ṣe e fẹnu sọ. Agbara Ẹmi Mimọ ti n dẹni lọkan yọ ọkan wọn bi ibukun Rẹ ti ba si ori awọn olootọ ati onigbagbọ ni ọna kikun.

Ni pẹlẹkutu ati tọwọtọwọ awọn ti wọn gba iṣẹ iranṣẹ naa sunmọ akoko ti wọn n reti lati pade Oluwa wọn. Laraarọ wọn ri gẹgẹ bi ojuṣe

wọn lati ri idaniloju wipe Ọlọrun gba wọn. Ọkan wọn wa ni iṣọkan, wọn si n gbadura fun ara wọn ati pẹlu ara wọn. Ni ọpọ igba wọn maa n pade ni ibi ti o farasin lati ba Ọlọrun sọrọ, igbe ẹbẹ wọn si n goke lọ si ọrun laarin awọn papa oko. Idaniloju wipe Olugbala tẹwọ gba wọn ṣe pataki si wọn ju onjẹ oojọ wọn lọ; ti ikuuku ba si bo ọkan wọn mọlẹ, wọn ko ni sinmi titi ti a fi fẹ kuro. Bi wọn ti ni imọlara oore ọfẹ ti n dariji ni, wọn wọna lati ri Ẹni ti ọkan wọn fẹ.

Ṣugbọn lẹẹkan si, wọn a tun ri ijakulẹ. Igba ti wọn n reti kọja, Olugbala wọn ko farahan. Won ti wọna fun wiwa Rẹ pẹlu igboya ti ko mi, bayii, ọkan wọn dabi ti Maria nigba ti o de ibi ti a sin Olugbala si, ti o ri wipe o ṣofo, o sọ pẹlu ẹkun wipe: "Wọn ti gbe Oluwa mi lọ, mi o si mọ ibi ti wọn gbe tẹ si." Johanu 20:13

Ẹmi ọwọ ati ibẹru wipe iṣẹ iranṣẹ naa le jẹ otitọ, fun igba diẹ jẹ ikoni nijanu fun awọn alaigbagbọ. Lẹyin ti akoko naa kọja, eyi ko kuro lẹẹkan naa; ni akọkọ, wọn ko le yọ fun iṣẹgun lori awọn ti a ja kulẹ; ṣugbọn nigba ti wọn ko ri aami ibinu Ọlọrun, ibẹru wọn kuro ni ọkan wọn, wọn si bẹrẹ iṣẹ ẹgan ati ifini ṣẹsin wọn. Ọpọ awọn ti wọn sọ wipe wọn gbagbọ ninu wiwa Oluwa ni wọn kọ igbagbọ wọn silẹ. Awọn ti wọn nigboya gidigidi ni ọgbẹ ọkan ninu igberaga wọn debi pe o ṣe wọn bi ẹnipe ki wọn sa kuro ninu aye. Bi Jonah, wọn ṣe aroye nipa Ọlọrun, wọn si yan iku dipo iye. Awọn ti wọn gbe igbagbọ wọn si ori ero ẹlomiran, ti ki i si i ṣe ọrọ Ọlọrun tun mura tan lati yi ero wọn pada. Awọn ẹlẹgan jere awọn alailagbara ati ojo sinu ẹgbẹ wọn, gbogbo awọn wọnyi parapọ lati kede wipe ko si ibẹru ati ireti mọ. Akoko ti kọja, Oluwa ko wa, aye le wa bakan naa fun ọpọ ẹgbẹrun ọdun.

Awọn onigbagbọ tootọ, ati onifọkansin ti fi ohun gbogbo silẹ nitori Kristi wọn si ni ipin ninu iwapẹlu Rẹ ju ti tẹlẹ lọ. Bi wọn ti gbagbọ, wọn ti fun araye ni ikilọ ti o kẹyin, wọn si reti wipe laipẹ a yoo gba wọn sinu awujọ Oluwa wọn ọrun ati awọn angẹli ọrun, ni ọna pupọ wọn ti yago kuro ninu awujọ awọn ti ko gba iṣẹ iranṣẹ naa. Pẹlu ifẹ ọkan ti o gbona, wọn gbadura pe: "Ma a bọ Jesu Oluwa, ma a bọ kankan." Ṣugbọn ko wa. Ni bayii, lati gbe ẹru wuwo aye yii, ati lati fi ara da eebu ati ẹgan awọn ẹlẹgan aye jẹ idanwo nla igbagbọ ati ti suuru.

Sibẹ ijakulẹ yii ko tobi to eyi ti awọn ọmọ ẹyin ni iriri rẹ ni igba ti Kristi wa ni akọkọ. Nigba ti Jesu gun kẹtẹkẹtẹ pẹlu iṣẹgun wọ Jerusalẹmu, awọn atẹle Rẹ gbagbọ wipe O ti fẹ gun ori itẹ Dafidi, ki O si gba Israeli kuro ni ọwọ awọn aninilara wọn. Pẹlu ireti nla ati iwọna pẹlu ayọ, wọn n figagbága ni bibọwọ fun Ọba wọn. Ọpọ ni wọn tẹ aṣọ wọn silẹ lati jẹ ki O rin kọja, tabi ki wọn tẹ màrìwò siwaju Rẹ. Pẹlu ayọ wọn parapọ lati kigbe wipe: "Hosanna si Ọmọ Dafidi!" Nigba ti awọn

Farisi fẹ ki Jesu da awọn ọmọ ẹyin Rẹ lẹkun, nitori ti ariwo ayọ wọn n bi wọn ninu, o si n damu alaafia wọn, O dahun: “Bi awọn wọnyi ba dakẹ, lọgan ni awọn okuta yoo kigbe sita.” Luku 19:40. Asọtẹlẹ nilati wa si imuṣẹ. Awọn ọmọ ẹyin n mu erongba Ọlọrun wa si imuṣẹ; sibẹ wọn yoo ni ijakulẹ kikoro. Ṣugbọn ọjọ diẹ ni o tẹle nigba ti wọn ri Olugbala ti O n ku iku oró, ti wọn si tẹ Ẹ sinu iboji. Ireti wọn ko wa si imuṣẹ ni ọna ti wọn ro, ireti wọn si ku pẹlu Jesu. Igba ti Oluwa wọn jade pẹlu iṣẹgun lati inu iboji ni wọn to ri wipe a ti sọ gbogbo rẹ tẹlẹ ninu isọtẹlẹ ati pe “Kristi nilati jiya, ki o si ji dide kuro ninu ipo oku.” Iṣe 17:3.

Ẹẹdẹgbẹrin (500) ọdun ṣaaju, Oluwa ti kede nipasẹ woli Sekaraya wipe: “Ẹ bu sayọ, ẹyin ọmọbinrin Sioni, ẹ kigbe, ẹyin ọmọbinrin Jerusalẹmu: kiyesi Ọba rẹ n bọ wa sọdọ rẹ: O jẹ olododo O si ni igbala; onirẹlẹ, ti O n gun kẹtẹkẹtẹ O n gun ọmọ kẹtẹkẹtẹ.” Sekaraya 9:9. Bi awọn ọmọ ẹyin ba mọ wipe Kristi n lọ si ibi idajọ ati iku ni, wọn ki ba ti mu asọtẹlẹ yii ṣẹ.

Ni ọna kan naa Miller ati awọn akẹgbẹ rẹ mu isọtẹlẹ ṣẹ wọn si funni ni iṣẹ iranṣẹ eyi ti Imisi ti sọtẹlẹ wipe a yoo fun araye, ṣugbọn ti wọn ki ba ti fun ni bi wọn ba ni oye kikun nipa asọtẹlẹ ti o tọka si ijakulẹ wọn, ti o tun sọ nipa iṣẹ iranṣẹ miran ti a yoo waasu fun gbogbo orilẹ ede ki Oluwa to wa. A funni ni iṣẹ iranṣẹ angẹli akọkọ ati ekeji ni akoko ti o yẹ, wọn si ṣe iṣẹ ti Ọlọrun fẹ ki wọn ṣe.

Araye n woye, wọn n reti wipe, bi akoko naa ba kọja ti Kristi ko si fi ara han, a yoo kọ gbogbo eto ẹgbẹ Onireti silẹ. Ṣugbọn nigba ti ọpọlọpọ kọ igbagbọ wọn silẹ labẹ idanwo nla, awọn kan wa ti wọn duro gbọin. Awọn eso ẹgbẹ Onireti, ẹmi irẹlẹ ati yiyẹ ọkan wo, kikọ aye silẹ ati titun aye ẹni ṣe, eyi ti o tẹle iṣẹ wọn jẹri si wipe ti Ọlọrun ni. Wọn ko le sẹ wipe agbara Ẹmi Mimọ jẹri si iwaasu ipadabọ lẹẹkeji, wọn ko si le ri aṣiṣe kankan ninu iṣọwọṣiro akoko isọtẹlẹ. Eyi ti o lagbara julọ ninu awọn alatako wọn ko le bi agbekalẹ iṣọwọtumọ asọtẹlẹ wọn lulẹ. Laisi ẹri Bibeli, wọn ko le gba lati kọ ipo wọn silẹ ipo ti wọn de lẹyin ikẹkọ Bibeli pẹlu adura tọkantọkan, pẹlu ọkan ti Ẹmi Ọlọrun mi si ati ọkan ti o n gbina pẹlu agbara iwalaaye rẹ; ipo ti o duro gbọin bi o tilẹ jẹ wipe awọn olukọ ẹsin ti wọn lokiki ati awọn ọlọgbọn aye tako o kikankikan, eyi ti o duro bi o tilẹ jẹ wipe awọn sọrọsọrọ ati awọn ọmọwe tako o, bi o tilẹ jẹ wipe awọn ẹni iyi ati eniyan lasan ni awujọ fi ṣe ẹfẹ ti wọn si kẹgan rẹ.

Lootọ, ibaku wá lori ohun ti wọn n reti, ṣugbọn eyi ko le mi igbagbọ wọn ninu ọrọ Ọlọrun. Nigba ti Jonah waasu ninu igboro Ninefe wipe laarin ogoji ọjọ, a yoo pa ilu naa run, Oluwa gba irẹraẹnisilẹ awọn ara Ninefe, O si fi kun akoko oore ọfẹ won; sibẹ ọdọ Ọlọrun ni iṣẹ iranṣẹ

Jonah ti wa, a si dan Ninefe wo gẹgẹ bi ifẹ Rẹ. Awọn Onireti gbagbọ bakan naa wipe Ọlọrun dari wọn lati funni ni ikilọ nipa idajọ. Wọn sọ pe, “O ti dan ọkan gbogbo awọn ti wọn gbọ ọ wo, o si ta ifẹ fun ifarahan Oluwa ji; tabi o ti mu ikorira fun wiwa Rẹ wá eyi ti o jẹ wipe a ri ni bi o ti wu ki o mọ. O ti pa ala, . . . ki awọn ti wọn yoo yẹ ọkan ara wọn wo le mọ iha ẹni ti wọn yoo wa, bi o ba ṣe wipe Oluwa wa nigba naa—boya wọn a le kigbe wipe, ‘Kiyesi! Ọlọrun niyi, awa ti duro de E, yoo si gba wa;” tabi boya wọn a pe apata ati oke lati wo lu wọn lati le fi wọn pamọ kuro niwaju Ẹni ti o joko lori itẹ ati kuro lọwọ ibinu Ọdọ Aguntan. Gẹgẹ bi a ti gbagbọ, bayi ni Ọlọrun se dan awọn eniyan Rẹ wo, O dan igbagbọ wọn wo, O yẹ wọn wo, O si ri boya wọn a yipada ni akoko idanwo kuro ninu ipo eyi ti I ba ri wipe o dara lati fi wọn si; tabi boya wọn a kọ aye yii silẹ, wọn a si ni igbagbọ ninu ọrọ Ọlọrun patapata.”

Ero ọkan awọn ti wọn gbagbọ wipe Ọlọrun ni O n dari wọn ninu awọn iriri wọn latẹyin wa ni a ṣalaye ninu ọrọ William Miller: “Bi mo ba le tun aye mi gbe lẹẹkansi, pẹlu ẹri kan naa ti mo ni, ni tootọ si Ọlọrun ati eniyan, maa ṣe gẹgẹ bi mo ti ṣe.” “Mo ni ireti wipe mo ti fọ ẹjẹ awọn eniyan mọ kuro lara aṣọ mi. Mo mọ wipe, gẹgẹ bi o ti wa ninu agbara mi mo bọyọ kuro ninu ẹbi idalẹbi wọn.” Eniyan Ọlọrun yii kọwe wipe, “Bi o tilẹ jẹ wipe mo ti ni ibaku lẹẹmeji, mi o tẹba, tabi ni irẹwẹsi. . . . Ireti mi ninu wiwa Kristi si lagbara bii ti tẹlẹ. Mo ṣe ohun ti mo ri gẹgẹ bi ojuṣe mi lẹyin ayẹwo fun ọpọlọpọ ọdun. Bi mo ba ṣe aṣiṣe, ni ìhà aanu ni mo ṣe si, lati fẹran awọn arakunrin mi, ati igbagbọ mi nipa ojuṣe mi si Ọlọrun.” “Ohun kan ni mo mọ, mi o waasu ohunkohun ayafi eyi ti mo gbagbọ, Ọlọrun si wa pẹlu mi; agbara Rẹ fi ara han ninu iṣẹ naa, èrè pupọ si ni o ti ibẹ jade.” “Ọpọ eniyan, gẹgẹ bi awọn eniyan ti ri, ni wọn kọ ẹkọ Iwe Mimọ nipasẹ iwaasu akoko naa; nitori eyi, nipasẹ igbagbọ ati ẹjẹ Kristi, wọn ti ba Ọlọrun laja.” Mi o bẹbẹ fun ẹrin agberaga, mi o bẹru nitori ifajuro aye. Bayi, mi o ni ra oju rere wọn, tabi ki n rekọja ojuṣe mi lati dan wọn wo. Mi o ni wa ẹmi mi lọwọ wọn, tabi ki n lọra lati padanu rẹ, bi Ọlọrun ninu iṣọwọṣiṣẹ Rẹ ba ṣe bẹẹ ṣe eto rẹ.”

Ọlọrun ko kọ awọn eniyan Rẹ silẹ; Ẹmi Rẹ si wa pẹlu awọn ti ko fi igbonara sẹ imọlẹ ti wọn gba, ki wọn si kẹgan ẹgbẹ Onireti. Awọn ti a n danwo ti wọn duro ni akoko wahala yii ri ọrọ imoriya ati ikilọ ninu Episteli Heberu: “Maṣe sọ igboya rẹ nu, eyi ti o ni èrè nla. Nitori ẹ nilo suuru, wipe lẹyin ti ẹyin ba ti ṣe ifẹ Ọlọrun, ẹ yoo gba ileri naa. Nitori fun igba diẹ, Ẹni ti yoo wa yoo wa, ki yoo si pẹ. Olododo yoo wa nipa igbagbọ: ṣugbọn bi ẹnikẹni ba fa sẹyin, ọkan Mi ki yoo nifẹ si. Ṣugbọn awa ko si lara awọn ti wọn fa sẹyin sinu iparun; bikoṣe lara awọn ti wọn gbagbọ si igbala ọkan.” Heberu 10: 35—39.

Wipe ijọ ni akoko ikẹyin ni a gba niyanju yii farahan ninu awọn ọrọ ti wọn tọka si bi wiwa Oluwa ti sunmọ: “Fun igba diẹ si, Ẹni ti yoo wa yoo wa, ki yoo si pẹ.” O si han kedere wipe yoo dabi ẹnipe ifasẹyin wa, yoo si dabi ẹnipe o pẹ ki Oluwa o to de. Ikilọ ti a fifunni nibi ni i ṣe ni pataki julọ pẹlu iriri awọn Onireti ni akoko yii. Awọn ti a ba sọrọ nibi wa ninu ewu atidoju igbagbọ wọn bolẹ. Wọn ti ṣe ifẹ Ọlọrun ni titẹle itọsọna Ẹmi Rẹ ati ọrọ Rẹ; sibẹ wọn ko ni oye erongba Rẹ ninu iriri wọn latẹyin wa, bẹẹ si ni wọn ko ni oye ọna ti o wa niwaju wọn, wọn wa ninu idanwo boya ki wọn ṣe iyemeji, boya Ọlọrun ni O n dari wọn lootọ. Ni akoko yii, awọn ọrọ wọnyi nitumọ: “Olododo yoo wa nipa igbagbọ.” Bi imọlẹ nla ti “igbe ni oruganjọ” ti tan si ọna wọn, wọn ri bi asọtẹlẹ ti n ṣipaya ti awọn ami ti wọn n ṣẹ kankan n sọ fun wọn wipe wiwa Kristi sunmọle, wọn ti rin, gẹgẹ bi a ti le sọ nipa ohun ti oju wọn ri. Ṣugbọn nisinsinyi, ti ori wọn tẹba nitori ireti wọn ti o jakulẹ, nipa igbagbọ ninu Ọlọrun ati ninu ọrọ Rẹ ni wọn fi le duro. Awọn araye ti n kẹgan sọ wipe: “A ti tan yin jẹ. Ẹ kọ igbagbọ yin silẹ, ki ẹ si sọ wipe Satani ni o n dari ẹgbẹ yii.” Ṣugbọn ọrọ Ọlọrun sọ wipe: “Bi ẹnikẹni ba fa sẹyin, ọkan Mi ki yoo ni inudidun si.” Lati wa kọ igbagbọ wọn silẹ bayi, ki wọn si sẹ agbara Ẹmi Mimọ ti o ti wa pẹlu iṣẹ iranṣẹ wọn, yoo tumọ si fifasẹyin sinu iparun. Ọrọ Pọlu gba wọn niyanju lati duro ṣinṣin: “Ẹ maṣe sọ igboya yin danu;” “ẹ nilo suuru,” “fun igba diẹ si Ẹni ti yoo wa yoo wa, ki yoo si pẹ.” Ohun kan ṣoṣo ti o tọna ti wọn le ṣe ni lati mu imọlẹ ti wọn ti gba lati ọdọ Ọlọrun lọkunkundun, ki wọn si di ileri Rẹ mu, ki wọn tẹsiwaju lati wá inu Iwe Mimọ, ki wọn si fi suuru duro ki wọn si maa ṣọna lati gba imọlẹ si.

23

Kini Ibi Mimọ?

Ẹsẹ iwe mimọ ti i ṣe ipilẹ ati òpó aarin gungun ti ipadabọ nì kede wipe: “Titi fi di ẹgbẹrun meji o le ọgọrun mẹta (2300) ọjọ ni a o ṣe iwẹnumọ ibi mimọ.” Danịeli 8:14. Awọn wọnyi jẹ ọrọ ti ko ṣajeji si awọn onigbagbọ ninu wiwa Oluwa laipẹ. Ọpọ ni wọn sọ asọtẹlẹ yii ni asọtunsọ gẹgẹ bi akọmọna igbagbọ wọn. Gbogbo wọn ro wipe lori iṣẹlẹ ti a sọtẹlẹ naa ni afojusun wọn, ti o mọlẹ julọ ati ireti ti wọn fẹran julọ duro le lori. Awọn ọjọ asọtẹlẹ wọnyi ni a fihan wipe wọn pari ni akoko ikore ni 1844. Ni ibamu pẹlu awọn Kristẹni yooku, awọn Onireti nigba naa gbagbọ wipe aye, tabi diẹ ninu rẹ, ni ibi mimọ. Wọn ni oye wipe ṣiṣe iwẹnumọ ibi mimọ tumọ si fifọ aye mọ pẹlu ina ọjọ nla ikẹyin, ati wipe eyi yoo ṣẹlẹ ni asiko ipadabọ lẹẹkeji. Eyi ni o fa akotan ọrọ wipe Kristi yoo pada wa si aye ni 1844.

Ṣugbọn akoko ti a yan kọja, Oluwa ko si fi ara han. Awọn onigbagbọ mọ wipe ọrọ Ọlọrun ko le baku; o nilati jẹ wipe itumọ ti wọn fun isọtẹlẹ ni kò peye; ṣugbọn nibo ni aṣiṣe naa wa? Ọpọ ni wọn fi igbonara yanju iṣoro naa nipa sisọ wipe 2300 ọjọ ko pari ni 1844. Wọn ko ri idi fun eleyi ju wipe Kristi ko wa ni akoko ti wọn reti Rẹ. Wọn sọ pe bi ọjọ asọtẹlẹ ba pari ni 1844, Kristi i ba ti pada wa lati ṣe iwẹnumọ ibi mimọ nipa fifọ aye mọ pẹlu ina; ati pe nigba ti ko i tii wa, awọn ọjọ naa koi tii le pari.

Lati gba ọrọ yii ni lati kọ iṣọwọka akoko isọtẹlẹ ti wọn gba tẹlẹ silẹ. 2300 ọjọ ni a ri wipe o bẹrẹ ni igba ti aṣẹ Artaxerxes lati ṣe atunṣe Jerusalẹmu ati lati tun kọ bẹrẹ ni igba ikore 457 B. C. Bi a ba mu eleyi gẹgẹ bi akoko ibẹrẹ, ibaṣepọ ti o peye wa ninu imuṣẹ gbogbo awọn iṣẹlẹ ti a sọ tẹlẹ ninu alaye akoko naa ninu Danịeli 9:25—27.

Ọkan din laadọrun ọsẹ, 483 ọdun akọkọ ninu 2300 ọdun, yoo lọ de akoko Mesaya, Ẹni Ami Ororo; ati itẹbọmi Kristi ati ifami ororo yan Ẹmi Mimọ, A. D. 27, akoko gan pato ti o mu alaye naa ṣẹ. Ni aarin ọsẹ ti o kẹyin ninu aadọrin ọsẹ, a o ge Mesaya kuro. Ọdun mẹta aabọ lẹyin itẹbọmi Rẹ, a kan Kristi mọ agbelebu ni akoko riru ewé ni A. D. 31. Aadọrin ọsẹ tabi 490 ọdun, yoo ni i ṣe pẹlu awọn Ju ni pato. Ni opin akoko yii orilẹ ede naa fi ontẹ lu bi o ti kọ Kristi silẹ nipa ṣiṣe inunibini si awọn ọmọ ẹyin Rẹ, awọn ọmọ ẹyin si tọ awọn Keferi lọ ni A. D. 34. Nigba ti ọdun 490 ninu 2300 ọdun ti pari, yoo ku 1810 ọdun silẹ. Lati A. D. 34, 1810 lọ de 1844. Angẹli naa sọ wipe, “Nigba naa ni a o ṣe iwẹnumọ ibi mimọ.” Gbogbo alaye asọtẹlẹ ti o ṣaaju ni wọn wa si imuṣẹ, laisi ariyanjiyan, ni akoko ti a la kalẹ.

Pẹlu iṣọwọka akoko yii, ohun gbogbo ni o han kedere ti o tun wa ni irẹpọ, ayafi wipe a ko ri ki iṣẹlẹ kankan ṣẹlẹ ki o dahun si ṣiṣe iwẹnumọ ibi mimọ ni 1844. Lati sọ wipe ọjọ naa ko pari ni akoko naa ni lati sọ gbogbo rẹ sinu idarudapọ ati lati kọ ipo ti a gbe kalẹ nipa imuṣẹ asọtẹlẹ ti ko yẹsẹ silẹ.

Ṣugbọn Ọlọrun ni O dari awọn eniyan Rẹ ninu ẹgbẹ nla ti ipadabọ; agbara ati ogo Rẹ tẹle iṣẹ wọn, ko si ni gba ki o pari sinu okunkun ati ijakulẹ, ki a wa kẹgan rẹ gẹgẹ bi èké ati irusoke ifẹ ọkan. Ko fi ọrọ Rẹ silẹ ninu iyemeji ati aidaniloju. Bi o tilẹ jẹ wipe ọpọ ni wọn kọ iṣọwọka akoko isọtẹlẹ ti wọn n lo tẹle silẹ ti wọn si sọ wipe ẹgbẹ ti o dide latari rẹ ko tọna, awọn miran ko fẹ fi koko igbagbọ ati iriri ti Iwe Mimọ ti lẹyin, ti Ẹmi Ọlọrun tun jẹri si silẹ. Wọn gbagbọ wipe wọn lo agbekalẹ itumọ ti o peye ninu bi wọn ti n kẹkọ isọtẹlẹ, ati wipe ojuṣe wọn ni lati di otitọ ti wọn ri mu ṣinṣin, ki wọn si tẹsiwaju ninu ẹkọ Bibeli. Pẹlu adura atọkanwa, wọn ṣe atunyẹwo ipo wọn, wọn si kẹkọ Iwe Mimọ lati le ri aṣiṣe wọn. Nigba ti wọn ko ri aṣiṣe ninu iṣọwọka akoko isọtẹlẹ wọn, wọn ṣe ayẹwo finifini koko ọrọ ti a pe ni ibi mimọ.

Ninu ayẹwo wọn, wọn kọ wipe ko si ẹsẹ Iwe Mimọ lati fi gbe igbagbọ ti o wọpọ wipe aye yii ni ibi mimọ lẹsẹ; ṣugbọn wọn ri alaye kikun lori ibi mimọ ninu Bibeli, irisi rẹ, ibi ti o wa ati awọn eto inu rẹ; ẹri awọn onkọwe mimọ sọ ọ ni ọna ti o yeni yekeyeke ti ko fi yẹ ki ibeere o wa. Apostoli Pọlu ninu iwe Heberu sọ wipe: “Majẹmu iṣaaju paapaa ni ilana ijọsin ti o mọ, ati ibi mimọ kan ti a ṣe fun ijọsin ninu aye yii. Nitori pe a pa agọ kan; eyi ti iṣaaju ninu eyi ti ọpa fiitila ati tabili ati akara ifihan gbe wa, eyi ti a n pe ni ibi mimọ. Ati lẹyin aṣọ ìkélé keji, oun ni agọ ti a n pe ni ibi mimọ julọ; ti o ni awo turari wura ati apoti majẹmu ti a fi wura yi ara rẹ ka, ninu eyi ti ikoko wura ti mana wa ninu rẹ gbe wa, ati ọpa Aroni ti o rudi, ati awọn walaa majẹmu; ati lori rẹ ni awọn kerubu ogo ti wọn ṣiji bo itẹ naa.” Heberu 9:1—5.

Ibi mimọ ti Pọlu n sọ nibi ni agọ ti Mose pa, eyi ti Ọlọrun palaṣẹ fun gẹgẹ bi ibugbe Ẹni Giga julọ ni aye. “Jẹ ki wọn pa agọ kan fun Mi; ki Emi le gbe ni aarin wọn” (Eksodu 25:8), ni aṣẹ ti a fun Mose nigba ti o wa ni ori oke pẹlu Ọlọrun. Awọn ara Israeli n rin ninu aginju, a si pa agọ naa ni ọna ti a fi le gbe lati ibi kan de ekeji; sibẹ o jẹ ile ti o rẹwa. Ogiri rẹ jẹ igi ti a fi wura kun jọjọ, ti a gbe sinu ihò fadaka, nigba ti orule rẹ jẹ orisi aṣọ ìlekè, tabi aṣọ ti a fi n bo nnkan, awọ, aṣọ ọgbọ wiwe ti a ya aworan kerubu si. Gbọngan ita, ti o ni pẹpẹ ẹbọ sisun, agọ naa funra rẹ ni yara meji ti a pe ni ibi mimọ ati ibi mimọ julọ, ti a fi aṣọ ìkélé ti o rẹwa da, tabi iboju; iru iboju kan naa ni o bo ẹnu ọna yara akọkọ.

Ọpa fitila wa ni iha gusu ninu ibi mimọ pẹlu awọn itanna meje rẹ ti n fun ibi mimọ ni imọlẹ lọsan loru; ni iha ariwa ni tabili akara ifihan wa; niwaju iboju ti o pin ibi mimọ ati ibi mimọ julọ si meji ni pẹpẹ turari oniwura wa, nibi ti eefin oloorun didun, pẹlu adura Israeli ti n goke lọ siwaju Ọlọrun lojoojumọ.

Ni ibi mimọ julọ ni apoti kekere kan wa, apoti ti a fi igi ojulowo ṣe ti a tun fi wura kun, nibi ti a gbe walaa okuta si, nibẹ ni Ọlọrun kọ Ofin Mẹwa si. Ni ori apoti naa ni itẹ aanu wa eyi ti o duro gẹgẹ bi ibori apoti mimọ naa, iṣẹ ọnà ti o dara, ti a gbé kerubu meji le lori, ọkan lẹgbẹ kini ati ekeji, wura ojulowo ni a fi ṣe gbogbo wọn. Ninu yara yii ni Ọlọrun ti n fi ara han ninu ikuuku ogo laarin awọn kerubu.

Lẹyin ti awọn Heberu tẹdo si Kenani, tẹmpili Solomoni ni o rọpo agọ yii, bi o tilẹ jẹ wipe o jẹ ile, ti o tun tobi ju u lọ, odiwọn kan naa ni wọn lo, a tun ṣe e lọṣọ bakan naa. Bayi ni ibi mimọ naa ṣe wa—ayafi igba ti o wa ni ahoro ni akoko Danieli—titi fi di igba ti awọn Romu fi pa a run ni A. D. 70.

Ibi mimọ kan ṣoṣo ti o wa ninu aye ri niyii, ohun nikan ni Bibeli sọ nipa rẹ. Eyi ni Pọlu pe ni ibi mimọ ti majẹmu akọkọ. Ṣugbọn ṣe majẹmu tuntun ko ni ibi mimọ ni?

Ni yiyi si iwe Heberu, awọn ti wọn n wa otitọ ri wipe a le ri dimu ninu ọrọ Pọlu ti a ka loke wipe majẹmu keji, tabi majẹmu tuntun ni ibi mimọ: “Majẹmu iṣaaju paapa ni ilana ijọsin ti o jẹ mimọ, ati ibi mimọ kan ti a ṣe fun ijọsin ninu aye yii.” Lilo ọrọ ti a pe ni “paapaa” fihan wipe Pọlu ti mẹnuba ibi mimọ yii tẹlẹ. Bi a ba pada sẹyin lọ si ori kẹjọ, a ka wipe: “Njẹ pataki ohun ti a n sọ ni eyi: Awa ni iru Olori alufa kan, ẹni ti o joko ni ọwọ ọtun itẹ Ọlanla ninu awọn ọrun; Alufa ibi mimọ, ati agọ tootọ, eyi ti kii ṣe eniyan ni o kọ bikoṣe Oluwa.” Heberu 8:1, 2.

Nibi ni a ti fi ibi mimọ majẹmu tuntun han. Eniyan ni o kọ ibi mimọ ti majẹmu akọkọ, Mose ni o kọ; Oluwa ni o kọ eyi , ki i ṣe eniyan. Ninu

ibi mimọ yẹn awọn alufa ti aye yii ni wọn n ṣe iṣẹ isin wọn nibẹ; ninu eyi, Kristi, Olu Alufa wa nla, ni O n ṣesin ni ọwọ ọtun Ọlọrun. Ibi mimọ kan wa ni aye, ikeji wa ni ọrun.

Siwaju si, a pa agọ ti Mose kọ ni ibamu pẹlu apẹẹrẹ kan. Oluwa ti pa a laṣẹ: "Gẹgẹ bi gbogbo eyi ti mo fi han ọ, nipa apẹẹrẹ agọ, ati apẹẹrẹ gbogbo ohun elo inu re, bẹẹ ni ki ẹyin ki o ṣe e." Siwaju si, a tun pa aṣẹ yii, "Si kiyesi ki iwọ o ṣe wọn gẹgẹ bi apẹẹrẹ ti a fi han ọ lori oke." Eksodu 25:9, 40. Pọlu sọ wipe ibi mimọ akọkọ "jẹ apẹẹrẹ fun ti akoko yii, nibi ti a ti n ru ọrẹ ati ẹbọ;" wipe awọn ibi mimọ rẹ jẹ "apẹẹrẹ awọn ohun ti ọrun;" wipe awọn alufa ti wọn n mu ọrẹ wa gẹgẹ bi ofin n ṣe e "gẹgẹ bi apẹẹrẹ ati ojiji awọn ohun ti ọrun," ati pe "Kristi ko wọ awọn ibi mimọ ti a fi ọwọ kọ, eyi ti i ṣe aworan ibi mimọ tootọ; ṣugbọn sinu ọrun funra Rẹ, ni bayi lati fi ara han niwaju Ọlọrun fun wa." Heberu 9:9, 23; 8:5; 9:24.

Ibi mimọ ni ọrun, nibi ti Jesu ti n ṣiṣẹ fun wa, òhun ni ibi mimọ gan, eyi ti ibi mimọ ti Mose kọ jẹ apẹẹrẹ fun. Ọlọrun fi Ẹmi Rẹ si ori awọn ti wọn kọ ibi mimọ aye. Iṣẹ ọna ti wọn fi kọ jẹ afihan ọgbọn ọrun. Awọn ogiri rẹ ni irisi wura pupọ, ti o n fi ina lati ara fitila meje ti ọpa fitila han ni gbogbo ọna. Tabili akara ifihan ati pẹpẹ turari n dan gbinrin bi wura ti a ṣe lọṣọ. Awọn aṣọ ileke didara ti a fi ṣe orule, ti a ṣe iṣẹ ọna awọn angẹli si pẹlu awọ búlù ati awọ aluko ati pupa, fi kun ẹwa ìrí naa. Lẹyin aṣọ ikele keji ni Shekinah mimọ wa, iri ifihan ogo Ọlọrun, ko si ẹni ti o le de iwaju rẹ ki o si ye ayafi olu alufa.

Ẹwa ti ko lafiwe agọ aye ṣe afihan fun oju eniyan awọn ogo tẹmpili ti ọrun nibi ti Kristi aṣaaju wa ti n ṣiṣẹ fun wa niwaju itẹ Ọlọrun. Ibugbe Ọba awọn ọba, nibi ti ẹgbẹẹgbẹrun ti n jọsin fun, ti ẹgbẹrun lọna ẹgbẹẹgbẹrun ti duro niwaju Rẹ (Daniẹli 7:10); tẹmpili yii kun fun ogo itẹ ayeraye, nibi ti awọn serafu, awọn ẹṣọ rẹ ti n dan, n bo oju wọn fun ijọsin, le ri afarawe ninu ile ti o rẹwa julọ ti eniyan kọ, ṣugbọn ti o jẹ ifihan ti o ri baibai ni ti titobi ati ogo rẹ. Sibẹ awọn otitọ ti wọn ṣe pataki nipa ibi mimọ ti ọrun ati iṣẹ nla ti a n ṣe nibẹ fun irapada eniyan ni ibi mimọ aye ati awọn eto rẹ fi kọni.

Awọn yara mimọ ibi mimọ ti ọrun ni a ṣe afihan wọn pẹlu yara meji ninu ibi mimọ ni aye. Gẹgẹ bi a ti gba apostoli Johanu laaye lati ri tẹmpili Ọlọrun ni ọrun ninu iran, o ri "fitila meje ti n jo niwaju itẹ naa" nibẹ. Ifihan 4:5. O ri angẹli "ti o ni àwo turari wura; a si fun ni turari pupọ, ki o le ru u pẹlu adura awọn eniyan mimọ lori pẹpẹ wura ti o wa niwaju itẹ naa." Ifihan 8:3. Nibi a gba woli naa laaye lati ri abala akọkọ ninu ibi mimọ ni ọrun, o si ri "fitila meje" ati "pẹpẹ wura" nibẹ ni eyi ti ọpa fitila wura ati pẹpẹ turari ninu ibi mimọ ti aye duro fun wa. Lẹẹkan si, "a ṣi tẹmpili Ọlọrun silẹ" (Ifihan 11:19), o si wo inu

aṣọ ìkélé, ninu ibi mimọ julọ. Nibi ni o ti ri “apoti ẹri Rẹ,” ti apoti mimọ ti Mose kan ti a gbe ofin Ọlọrun si duro fun.

Bayi ni awọn ti wọn kẹkọ koko ọrọ naa ṣe ri ẹri aridaju wipe ibi mimọ wa ni ọrun. Mose kọ ibi mimọ aye ni ibamu pẹlu aworan ti a fi han an. Pọlu kọni wipe apẹẹrẹ naa ni ti ibi mimọ tootọ ti o wa ni ọrun. Johanu si jẹri si wipe oun ri ni ọrun.

Ninu tẹmpili ni ọrun, ibugbe Ọlọrun, a fi idi itẹ Rẹ lelẹ ni ododo ati idajọ. Ninu ibi mimọ julo ni ofin Rẹ wa, odiwọn nla fun ohun ti o tọna, eyi ti a o fi dan gbogbo eniyan wo. Apoti naa ti a gbe walaa ofin sinu rẹ ni a fi itẹ aanu bo, niwaju eyi ti Kristi ti n fi ẹjẹ Rẹ bẹbẹ nitori ẹlẹṣẹ. Bayii a ṣe ṣe afihan iṣọkan ti o wa laarin idajọ ati aanu ninu eto irapada eniyan. Ọgbọn ayeraye nikan ni o le pete iṣọkan yii, agbara ayeraye nikan ni o le mu wa si imuṣẹ; o jẹ iṣọkan ti o mu iyanu ati iyin kun gbogbo ọrun. Awọn kerubu ibi mimo ti aye n fi tọwọtọwọ boju wo itẹ aanu, eyi ti o ṣe afihan ifẹ ọkan ti ogun ọrun fi n ronu lori iṣẹ igbala. Eyi ni ohun ijinlẹ aanu eyi ti awọn angẹli n fẹ lati wo—wipe Ọlọrun le jẹ olododo nigba ti O n da ẹlẹṣẹ ti o ronupiwada lare, ti O si tun ibaṣepọ Rẹ ṣe pẹlu iran ti o ṣubu; wipe Kristi le rẹ ara Rẹ silẹ lati fa ọpọ awọn eniyan kuro ninu kòtò iparun ki O si fi aṣọ ododo Rẹ ti ko ni abawọn wọ wọn lati so wọn pọ mọ awọn angẹli ti ko lẹṣẹ, ki wọn si le maa gbe titi lae niwaju Oluwa.

Iṣẹ Kristi gẹgẹ bi alagbawi eniyan ni a sọ ninu asọtẹlẹ ti o rẹwa ti Sekaraya nipa Ẹni naa “ti orukọ rẹ n jẹ Ẹka.” Woli naa sọ pe: “Yoo kọ tẹmpili Oluwa; yoo si gbe ogo, yoo si ṣe akoso lori itẹ [Baba] Rẹ; yoo si jẹ alufa lori itẹ Rẹ: imọran alaafia yoo si wa laarin Awọn mejeeji.” Sekaraya 6:12, 13.

“Yoo kọ tẹmpili Oluwa.” Nipa irubọ ati ibalaja Rẹ, Kristi di ipilẹ ati onkọle ijọ Ọlọrun. Apostoli Pọlu tọka si I gẹgẹ bi “pataki Okuta igun ile; ninu ẹni ti gbogbo ile naa ti a n kọ ṣọkan pọ, n dagba soke ni tẹmpili mimọ ninu Oluwa: ninu ẹni ti” o sọ wipe, “a kọ papọ fun ibugbe Ọlọrun nipasẹ Ẹmi.” Efesu 2: 20—22

“Yoo ru ogo naa.” Kristi ni o ni ogo irapada iran ti o baku. Titi de ayeraye, orin awọn ti a rapada yoo jẹ: “Si Ẹni ti o fẹ wa ti o si wẹ wa mọ kuro ninu ẹṣẹ wa ninu ẹjẹ ara Rẹ, . . . ti Rẹ ni ogo ati ijọba lae ati laelae.” Ifihan 1:5, 6.

“Yoo joko yoo si ṣe akoso lori itẹ Rẹ; yoo si di alufa lori itẹ Rẹ.” Ki i ṣe “lori itẹ ogo Rẹ” nisinsinyii; ijọba ogo koi tii bẹrẹ. O di igba ti iṣẹ ibalaja Rẹ ba pari ki Ọlọrun to “fun ni itẹ Dafidi baba Rẹ,” ijọba ti “ki yoo lopin.” Luku 1:32, 33. Gẹgẹ bi alufa, Kristi wa pẹlu Baba bayii lori itẹ Rẹ. Ifihan 3:21. Ẹni ti o “fi ara da ẹdun wa, ti o gbe ibinujẹ wa,” ti “a danwo ninu ohun gbogbo gẹgẹ bi tiwa, sibẹ ti O wa ni ailẹṣẹ” ki o baa

le “ran awọn ti a n danwo lọwọ” O wa ni ori itẹ pẹlu Ẹni ayeraye, Ẹni ti a ko da. “Bi ẹnikẹni ba dẹṣẹ, a ni alagbawi kan pẹlu Baba.” Aisaya 53:4; Heberu 4:15; 2:18; 1 Johanu 2:1. Ẹbẹ Re ni ara ti a gún, ti a fọ, igbesi aye ti ko ni abawọn. Ọwọ ti a ṣa lọgbẹ, ẹgbẹ ti a gun loko, ẹṣẹ ti a bajẹ n bẹbẹ fun eniyan ti o ṣubu, ti a ra irapada rẹ pẹlu ohun ti a ko le diye le.

“Imọran alaafia yoo si wa laarin Awọn mejeeji.” Ifẹ Baba, ti ko kere ni ọnakọna si ti Ọmọ ni orisun igbala fun iran ti o sọnu. Jesu sọ fun awọn ọmọ ẹyin Rẹ ki O ti lọ wipe: “Mi o sọ fun yin wipe maa bẹ Baba nitori yin: nitori ti Baba funra Rẹ fẹran yin.” Johanu 16:26, 27. Ọlọrun wa “ninu Kristi, O n ba araye laja pẹlu ara Rẹ.” 2 Kọrintin 5:19. Ninu iṣẹ iranṣẹ ninu ibi mimọ ti oke, “imọran alaafia yoo wa laarin awọn mejeeji.” “Ọlọrun fẹ araye to bẹẹ gẹẹ, ti O fi Ọmọ bibi Rẹ kan ṣoṣo funni, pe ẹnikẹni ti o ba gbagbọ ninu Rẹ ko ni ṣegbe, ṣugbọn yoo ni iye ainipẹkun.” Johanu 3:16.

A dahun ibeere, Kini ibi mimọ? ninu Bibeli ni ọna ti o han kedere. Ọrọ ti a pe ni “ibi mimọ,” bi a ti lo o ninu Bibeli tọka si, ni akọkọ agọ ti Mose pa, gẹgẹ bi aworan ohun ti ọrun; ni ẹẹkeji, si “agọ tootọ” ni ọrun, eyi ti ibi mimọ ti aye n tọka si. Nigba ti Jesu ku isin ti o n tọka si eyi ti n bọ pari. “Ibi mimọ tootọ” ni ọrun ni ibi mimọ ti majẹmu tuntun. Bi asọtẹlẹ Danieli 8:14 ti wa si imuṣẹ ni akoko ti wa yii, ibi mimọ ti o n tọka si nilati jẹ ibi mimọ ti majẹmu tuntun. Ni opin 2300 ọjọ, ni 1844, ko si ibi mimọ ni aye fun ọpọlọpọ ọdun. Bayii, asọtẹlẹ “Titi fi di 2300 ọjọ; nigba naa ni a o ṣe iwẹnumọ ibi mimọ,” laiṣe aniani n tọka si ibi mimọ ti ọrun.

Ṣugbọn a koi ti i dahun ibeere ti o ṣe pataki julọ: Kini ṣiṣe iwẹnumọ ibi mimọ? Isin kan wa ninu ibi mimọ ti aye ti a ṣe alaye rẹ ninu Iwe Mimọ Majẹmu Laelae. Ṣugbọn ṣe ohunkohun wà ni ọrun lati fọ mọ bi? Ninu Heberu 9, a ṣe ikọni nipa fifọ ibi mimọ ti aye ati ti ọrun mọ ni ọna ti o han kedere. “O si fẹrẹ jẹ wipe ohun gbogbo ni a fi ẹjẹ wẹ mọ nipa ofin; ati laisi itajẹ silẹ ko si idariji fun ẹṣẹ. Nitori naa o di dandan ki a fi iwọnyi [ẹjẹ ẹranko] wẹ apẹẹrẹ awọn ohun ti n bẹ ni ọrun mọ; ṣugbọn awọn ohun ti ọrun funra wọn pẹlu ẹbọ ti o dara ju iwọnyi lọ” (Heberu 9:22, 23), ani ẹjẹ Kristi ti o ṣe iyebiye.

A nilati ṣe ifọmọ, ni ti apẹẹrẹ ati ti ojulowo isin naa pẹlu ẹjẹ: ni titi akọkọ pẹlu ẹjẹ ẹranko, ni ti ti ikẹyin pẹlu ẹjẹ Kristi. Pọlu sọ gẹgẹ bi idi ti a nilati fi ṣe iwẹnumọ yii pẹlu ẹjẹ pe, laisi itajẹsilẹ ko si idariji fun ẹṣẹ. Idariji tabi mimu ẹṣẹ kuro, ni iṣẹ ti a nilati ṣe. Ṣugbọn bawo ni ẹṣẹ ṣe nii ṣe pẹlu ibi mimọ, boya ni ọrun tabi lori ilẹ aye? A le kọ eyi nipa wiwo isin ti ṣe apẹẹrẹ; nitori alufa ti n ṣe isin ni aye jọsin gẹgẹ bi “apẹẹrẹ ati ojiji si awọn ohun ti ọrun.” Heberu 8:5.

Iṣẹ iranṣẹ ibi mimọ ni aye wa ni abala meji; awọn alufa ti wọn n ṣe isin ojoojumọ ni ibi mimọ, nigba ti olu alufa n ṣe iṣẹ pataki iwẹnumọ ẹṣẹ ni ẹẹkan lọdun ninu ibi mimọ julọ, fun afọmọ ibi mimọ. Lojoojumọ, ẹlẹṣẹ ti o ba ronupiwada n mu ọrẹ rẹ wa si ẹnu ọna agọ, yoo gbe ọwọ rẹ le ori ohun irubọ ti ko lẹṣẹ. A yoo wa pa ẹranko naa.

"Laisi itajẹsilẹ," apostoli naa sọ wipe ko si idariji fun ẹṣẹ. "Ẹmi ẹran ara wa ninu ẹjẹ." Lefitiku 17:11. Ofin Ọlọrun ti a ru nilo ẹmi arufin. Ẹjẹ, ti o duro fun ẹmi ti ẹlẹṣẹ padanu, ẹni ti ohun irubọ n ru ẹbi rẹ, ni alufa a gbe lọ si ibi mimọ ti yoo si wọn siwaju aṣọ ikele eyi ti o bo apoti ti ofin, ti ẹlẹṣẹ ru wa ninu rẹ. Nipasẹ isin yii, nipasẹ ẹjẹ, ni ọna apẹẹrẹ, a ti gbe ẹṣẹ naa lọ sinu ibi mimọ. Ni igba miran, a ko ni gbe ẹjẹ naa lọ si ibi mimọ; ṣugbọn alufa ni yoo jẹ ẹran naa, gẹgẹ bi Mose ti dari awọn ọmọ Aroni wipe: "Ọlọrun ti fifun yin lati ru ẹṣẹ ijọ." Lefitiku 10:17. Awọn isin mejeeji tumọ si gbigbe ẹṣẹ lati ọdọ ẹlẹṣẹ wa sinu ibi mimọ.

Iru awọn iṣẹ ti n lọ lojoojumọ, jalẹ ọdun niyii. Bayii ni a ṣe n gbe awọn ẹṣẹ Israeli lọ si ibi mimọ, a wa nilo iṣẹ pataki lati mu wọn kuro. Ọlọrun paṣẹ ki a ṣe iwẹnumọ ẹṣẹ fun abala mimọ mejeeji. "Yoo ṣe iwẹnumọ fun ibi mimọ, nitori aimọ awọn ọmọ Israeli, ati nitori irekọja wọn ni gbogbo ẹṣẹ wọn: bakan naa ni yoo ṣe fun agọ ajọ, ti o wa laarin wọn ninu aimọ wọn." A nilati ṣe iwẹnumọ fun pẹpẹ lati "fọ ọ mọ, ati lati ya a si mimọ kuro ninu aimọ awọn ọmọ Israeli." Lefitiku 16:16, 19.

Ni ẹẹkan lọdun, ni Ọjọ nla Iwẹnumọ, alufa a wọ inu ibi mimọ julọ fun ifọmọ ibi mimọ. Iṣẹ ti a ṣe nibẹ pari iṣẹ isin jalẹ ọdun naa. Ni Ọjọ Iwẹnumọ, a o mu ewurẹ meji wa si ẹnu ọna agọ, a o si ṣẹ gègé le wọn, "gege kan fun Oluwa, ati ekeji fun ẹran ìyà." Ẹsẹ 8. A o pa ẹran tí gege Ọlọrun ṣe le lori gẹgẹ bi ẹbọ ẹṣẹ fun awọn eniyan. Alufa a si mu ẹjẹ rẹ wa sinu aṣọ ìkélé, yoo si wọn si ori itẹ aanu ati siwaju itẹ aanu. A yoo wọn ẹjẹ naa si ori pẹpẹ turari ti o wa niwaju aṣọ ikele.

"Aroni yoo si gbe ọwọ rẹ mejeeji le ori ewurẹ ti o wa laaye, yoo si jẹwọ gbogbo aiṣedeede awọn ọmọ Israeli, ati gbogbo irekọja wọn ninu gbogbo ẹṣẹ wọn, yoo gbe si ori ewurẹ naa, yoo si ran lọ sinu aginju lati ọwọ ẹni ti o yẹ: ewurẹ naa yoo ru gbogbo irekọja wọn lọ si ilẹ ti a ko tẹdo." Ẹsẹ 21, 22. Ẹran iya naa ko ni wọ agọ awọn ọmọ Israeli mọ lae, ẹni ti o mu u jade yoo wẹ ara rẹ pẹlu omi ki o to wọ inu agọ ijọ.

A ṣe gbogbo eto naa lati le jẹ ki awọn ọmọ Israeli mọ bi Ọlọrun ti jẹ mimọ to ati bi O ti korira ẹṣẹ to; ati lati fihan wọn wipe wọn ko le fi ara kan ẹṣẹ laidi alaimọ. Gbogbo eniyan ni o pan dandan fun lati jẹ ọkan wọn niya nigba ti iṣẹ iwẹnumọ ba n lọ lọwọ. A o pa gbogbo iṣẹ

tì, ti gbogbo ijọ Israeli yoo lo ọjọ naa ni irẹra-ẹni-silẹ niwaju Ọlọrun pẹlu adura ati awẹ ati yiyẹ ọkan ẹni wo finifini.

Iṣẹ apẹẹrẹ yii kọni ni awọn otitọ pataki nipa iwẹnumọ ẹṣẹ. A gba ohun miran ni ipo ẹlẹṣẹ; ṣugbọn ẹjẹ ohun irubọ ko pa ẹṣẹ naa rẹ. A pese ọna miran silẹ ti a o fi gbe wá sinu ibi mimọ. Nipa mimu ẹjẹ naa wa ẹlẹṣẹ gba aṣẹ ofin, o jẹwọ ẹbi rẹ ni riru ofin, o fi ifẹ rẹ han fun idariji nipa igbagbọ ninu Olurapada ti n bọ wa; ṣugbọn a ko yọ ọ silẹ patapata kuro ninu idalẹbi ofin. Ni Ọjọ Iwẹnumọ olu alufa, lẹyin ti o ba ti gba ọrẹ lati ọdọ ijọ, wọ inu ibi mimọ julọ pẹlu ẹjẹ ọrẹ yii, yoo sì wọn si ori itẹ aanu, taara sori ofin, lati le tẹ ẹtọ rẹ lorun. Nigba naa, ninu ojuṣe rẹ gẹgẹ bi olugbala, yoo gbe awọn ẹṣẹ naa si ori ara rẹ, yoo si gbe kuro ninu ibi mimọ. Yoo gbe ọwọ rẹ mejeeji sori ẹran iya naa, yoo jẹwọ gbogbo ẹṣẹ wọnyi le lori, ni bayi ni ọna apẹẹrẹ, o n gbe ẹṣẹ naa si ori ewurẹ lati ọdọ ara rẹ. Ewurẹ naa a wa ko wọn lọ, a wa gba wipe a ti pin wọn niya pẹlu awọn eniyan naa titi lae.

Iru eto ti a n ṣe "gẹgẹ bi apẹẹrẹ ati ojiji awọn ohun ti ọrun" niyi. Ohun ti a ṣe bi apẹẹrẹ ninu isin ibi mimọ ni aye ni a ṣe nitootọ ninu isin ni ibi mimọ ti ọrun. Lẹyin ti O goke re ọrun Olugbala wa bẹẹrẹ iṣẹ Rẹ gẹgẹ bi olu alufa wa. Pọlu sọ wipe: "Kristi ko wọ awọn ibi mimọ ti a fi ọwọ kọ, eyi ti i ṣe apẹẹrẹ ti otitọ, ṣugbọn sinu ọrun funra rẹ, bayi lati fi ara han niwaju Ọlọrun fun wa." Heberu 9:24.

Iṣẹ iranṣẹ alufa yipo ọdun nì abala akọkọ ní ibi mimọ, "ninu aṣọ ikele" eyi ti o jẹ ilẹkun ti o pin ibi mimọ niya pẹlu agbala ita, duro fun iṣẹ iranṣẹ ti Kristi bẹẹrẹ ni igba ti O goke re ọrun. Iṣẹ alufa ni iṣẹ iranṣẹ ojoojumọ lati mu ẹjẹ ọrẹ ẹbọ wa siwaju Ọlọrun, ati turari ti o n goke pẹlu adura Israeli. Bẹẹ gẹgẹ ni Kristi n bẹbẹ ẹjẹ Rẹ niwaju Baba nitori ẹlẹṣẹ, ti O tun n gbe adura awọn onigbagbọ ti wọn ronupiwada wa siwaju Rẹ, pẹlu oorun didun ti o ṣeyebiye ti ododo Rẹ. Iru iṣẹ iranṣẹ ti o n lọ ninu abala akọkọ ninu ibi mimọ ni ọrun niyi.

Nibẹ ni igbagbọ awọn ọmọ ẹyin tẹle lọ bi O ti n goke kuro ni oju wọn. Nibi ni ireti wọn wa, "ireti ti awa ni" Pọlu sọ pe "gẹgẹ bi idakọro fun ọkan, ti o daju ti o si duro gbọin, ati eyi ti o wọ inu aṣọ ikele, nibi ti aṣaju wa wọ lọ fun wa, ani Jesu, ti O di olu alufa titi lae." "Ki i ṣe pẹlu ẹjẹ ewurẹ tabi ọmọ malu, ṣugbọn pẹlu ẹjẹ ara Rẹ ni o wọ lẹẹkan ṣoṣo, lọ sinu ibi mimọ, lẹyin ti O ti gba irapada ainipẹkun fun wa." Heberu 6:19; 9:12.

Fun 1800 ọdun iṣẹ iranṣẹ yii tẹsiwaju ninu abala akọkọ ninu ibi mimọ. Ẹjẹ Kristi n bẹbẹ fun ẹlẹṣẹ, o jẹ ki wọn ri idariji ati itẹwọgba pẹlu Baba, sibẹ ẹṣẹ wọn si wa ninu iwe akọsilẹ. Gẹgẹ bi o ti wa ninu isin ti apẹẹrẹ, iṣẹ iwẹnumọ maa n wa ni opin ọdun, bẹẹ gẹgẹ ni kí iṣẹ Kristi fun irapada eniyan to pari, a yoo ṣe iṣẹ iwẹnumọ fun imukuro

ẹṣẹ kuro ninu ibi mimọ. Eyi ni eto ti o bẹrẹ nigba ti 2300 ọjọ pari. Ni igba naa, bi Danieli ti sọ ọ tẹlẹ, Olu Alufa wa wọ ibi mimọ julọ, lati ṣe abala ti o kẹyin ninu iṣẹ pataki Rẹ—lati ṣe iwẹnumọ ibi mimọ.

Gẹgẹ bi a ti n ṣe ni igba atijọ ti a n gbe ẹṣẹ awọn eniyan sori ẹbọ ẹṣẹ pẹlu igbagbọ ati nipasẹ ẹjẹ rẹ ti a n gbe, ní àmì, si ara ibi mimọ, bakan naa ninu majẹmu tuntun ẹṣẹ awọn ti wọn ba ronupiwada ni a gbe si ara Kristi nipa igbagbọ, ani ti a tun gba si ara ibi mimọ ti ọrun. Ati bi a ti n kasẹ ifọmọ ti ami nilẹ pẹlu imukuro ẹṣẹ ti wọn ba a jẹ, bẹẹ gẹgẹ ni ifọmọ tootọ ti ọrun yoo kasẹ nilẹ pẹlu imukuro, tabi pipa awọn ẹṣẹ ti a kọ silẹ nibẹ rẹ. Ṣugbọn ki a to le ṣe eyi, a nilati ṣe ayẹwo awọn iwe ti a kọ silẹ lati le mọ ẹni ti o yẹ fun anfani iwẹnumọ nipasẹ ironupiwada ẹṣẹ ati igbagbọ ninu Kristi. Fifọ ibi mimọ mọ, nitori naa ni i ṣe pẹlu iṣẹ iyẹwewo—iṣẹ idajọ. A nilati ṣe eyi ki Kristi to wá lati ra awọn eniyan Rẹ pada; nitori nigba ti O ba de, èrè Rẹ yoo wa pẹlu Rẹ lati fun olukuluku gẹgẹ bi iṣẹ rẹ. Ifihan 22:12.

Ni bayii awọn ti wọn rin ninu imọlẹ ọrọ isọtẹlẹ ri wipe, dipo ki O wa si aye ni opin 2300 ọjọ ni 1844, nigba naa ni Kristi wọ inu ibi mimọ julọ ni ibi mimọ ti ọrun lati ṣe iṣẹ aṣekagba ti iwẹnumọ ni imurasilẹ fun wiwa Rẹ.

A tun ri wipe, nigba ti ọrẹ ẹṣẹ tọka si Kristi gẹgẹ bi ẹbọ, ti olu alufa si duro fun Kristi gẹgẹ bi olugbala, ẹran iya duro fun Satani, ati olupilese ẹṣẹ, lori ẹni ti a yoo ko ẹṣẹ awọn ti wọn ronupiwada nitootọ le lori nikẹyin. Nigba ti olu alufa nipasẹ agbara ọrẹ ẹṣẹ ba gbe ẹṣẹ kuro ninu ibi mimọ, a gbe si ori ẹran iya. Nigba ti Kristi, nipasẹ agbara ẹjẹ Rẹ, ba mu ẹṣẹ awọn eniyan Rẹ kuro ninu ibi mimọ ti ọrun ni opin iṣẹ iranṣẹ Rẹ, yoo ko wọn sori Satani, ẹni ti yoo jẹbi wọn nikẹyin ni igba idajọ. A ran ẹran iya lọ si ilẹ ti a ko tẹdo, ti ko si ni pada si ajọ Israeli mọ lae. Bẹẹ gẹgẹ ni a yoo le Satani kuro niwaju Ọlọrun ati awọn eniyan Rẹ, ki yoo sì sí mọ ni igba iparun ikẹyin fun ẹṣẹ ati awọn ẹlẹṣẹ.

24

Ninu Ibi Mimọ Julọ

Koko ọrọ ibi mimọ ni kọkọrọ ti o tu aṣiri ijakulẹ 1844. O ṣi ilana otitọ ti o peye silẹ kedere, eyi ti o wa ni asopọ ati irẹpọ ti o fihan wipe Ọlọrun ni o dari ẹgbẹ ipadabọ nla ti o si n fi ojuṣe ti akoko yii han bi o ti n fi ipo ati iṣẹ awọn eniyan Rẹ han. Gẹgẹ bi awọn ọmọ ẹyin Jesu lẹyin aṣalẹ kikoro ti iporuuru ọkan ati ijakulẹ, “inu wọn dun lati ri Oluwa wọn,” bẹẹ gẹgẹ ni inu awọn ti wọn n fi igbagbọ wọna fun wiwa Rẹ lẹẹkeji dun. Wọn ti n reti Rẹ lati farahan ninu ogo lati fun awọn iranṣẹ Rẹ ni èrè. Bi ireti wọn ti jakulẹ, wọn gbe oju kuro lọdọ Jesu, wọn kigbe pẹlu Maria ni iboji: “Wọn ti gbe Oluwa mi lọ, n o si mọ ibi ti wọn gbe tẹ Ẹ si.” Bayi ní ibi mimọ julọ wọn tun ri Olu Alufa alaanu wọn lẹẹkansi, ti yoo farahan laipẹ gẹgẹ bi ọba ati olugbala wọn. Imọlẹ lati inu ibi mimọ tan imọlẹ si ohun ti o ti ṣẹlẹ sẹyin, ohun ti o n ṣẹlẹ lọwọlọwọ ati ọjọ iwaju. Wọn mọ wipe, bi i ti awọn ọmọ ẹyin akọkọ, awọn paapa kuna lati ni oye iṣẹ iranṣẹ ti wọn n waasu rẹ, bi o tilẹ jẹ wipe o tọna patapata. Ni wiwaasu rẹ wọn mu erongba Ọlọrun ṣẹ, iṣẹ wọn ko si jasi lasan ninu Oluwa. A “tun wọn bi sinu ireti ti n bẹ laaye,” wọn yọ “pẹlu ayọ ti o kun fun ogo ti ko ṣe e fẹnusọ.”

Asọtẹlẹ Danieli 8:14, “Titi di 2300 ọjọ; nigba naa ni a o ya ibi mimọ si mimọ;” ati iṣẹ iranṣẹ angẹli akọkọ, “Bẹru Ọlọrun ki ẹ si fi ogo fun; nitori ti wakati idajọ Rẹ de,” tọka si iṣẹ iranṣẹ Kristi ninu ibi mimọ julọ, si idajọ iyẹwewo, ki i si i ṣe si wiwa Kristi fun irapada awọn eniyan Rẹ ati iparun awọn eniyan buburu. Aṣiṣe naa ko si ninu iṣọwọka akoko isọtẹlẹ, ṣugbọn ninu iṣẹlẹ ti yoo ṣẹlẹ ni opin 2300 ọjọ. Aṣiṣe yii ni o fa ijakulẹ awọn onigbagbọ, sibẹ ohun gbogbo ti asọtẹlẹ yii sọ tẹlẹ, ati ohun gbogbo ti Iwe Mimọ gba wọn laaye lati reti ni wọn wa si

imuṣẹ. Ni akoko gan an ti wọn n kẹdun fun ijakulẹ ireti wọn, iṣẹlẹ ti iṣẹ iranṣẹ yii sọ tẹlẹ n wa si imuṣẹ, eyi ti o gbọdọ ṣẹlẹ ki Oluwa to wa lati fi ẹbun fun awọn iranṣẹ Rẹ.

Kristi lọ, kii ṣe sinu aye, bi wọn ti n reti Rẹ, ṣugbọn bi apẹẹrẹ ti ṣe afihan rẹ, O lọ sinu ibi mimọ julọ ninu tẹmpili Ọlọrun ni ọrun. Ọhun ni Danieli ṣe apejuwe Rẹ pẹlu wiwa, ni akoko yii, si ọdọ Arugbo Ọjọ: "Mo ri ninu awọn iran oru, si kiyesi, ẹnikan ti o dabi Ọmọ eniyan wa pẹlu ikuuku awọsanma, o si wá"—ki i ṣe sinu aye ṣugbọn—"si ọdọ Arugbo Ọjọ, a si mu wa siwaju Rẹ." Danieli 7:13.

Woli Malaki tun ṣe asọtẹlẹ nipa wiwa yii: "Oluwa, ẹni ti ẹyin n wa, yoo wa sinu tẹmpili Rẹ lojiji, ani Iranṣẹ majẹmu, ẹni ti inu yin dun si: kiyesi, yoo wa, ni Oluwa awọn ọmọ ogun wi." Malaki 3:1. Wiwa Oluwa sinu tẹmpili Rẹ jẹ ni ojiji ati ni airotẹlẹ fun awọn eniyan Rẹ. Wọn ko rò lati ri nibẹ. Wọn reti pe ki O wa si aye, "pẹlu ina ti n jo lati gbẹsan lara awọn ti ko mọ Ọlọrun, ti wọn ko si ṣe igbọran si iyinrere." 2 Tẹsalonika 1:8.

Ṣugbọn awọn eniyan koi ti i ṣetan lati pade Oluwa wọn. Iṣẹ igbaradi ṣi wa fun wọn lati ṣe. A yoo fun wọn ni imọlẹ ti yoo dari iye wọn sinu tẹmpili Ọlọrun ni ọrun; ati bi wọn ba ṣe n fi igbagbọ tẹle Olu Alufa wọn ninu iṣẹ iranṣẹ nibẹ, ojuṣe tuntun yoo fi ara han fun wọn. A yoo fun ijọ ni iṣẹ iranṣẹ ikilọ ati ikọni miran.

Woli naa sọ pe: "Tani yoo le duro ni ọjọ wiwa Rẹ? tani yoo si le duro nigba ti O ba fi ara han? nitori oun dabi ina ẹni ti n da fadaka, ati bi ọṣẹ afọṣọ: Oun o si joko bi ẹni ti n yọ, ti o si n da fadaka: yoo si fọ awọn ọmọ Lefi mọ, yoo si fọ wọn mọ bi wura oun fadaka, ki wọn le mu ọrẹ wa fun Oluwa ninu ododo." Malaki 3:2, 3. Awọn ti wọn ba wa laaye lori ilẹ aye nigba ti Kristi ba dawọ ẹbẹ duro ninu ibi mimọ loke yoo duro niwaju Ọlọrun mimọ laisi olubalaja. Aṣọ wọn nilati wa ni ailabawọn, a nilati fọ iwa wọn mọ kuro ninu ẹṣẹ nipasẹ ẹjẹ. Nipasẹ oore ọfẹ Ọlọrun ati iṣẹ atọkanwa wọn, wọn nilati di aṣẹgun ninu ijakadi pẹlu iwa buburu. Nigba ti idajọ iyẹwewo n lọ lọwọ ni ọrun, nigba ti a n mu ẹṣẹ awọn onigbagbọ ti wọn ronupiwada kuro ninu ibi mimọ, iṣẹ pataki ti ifọmọ, ti mimu ẹṣẹ kuro nilati maa lọ laarin awọn eniyan Ọlọrun ninu aye. Iṣẹ yii ni a ṣe afihan rẹ ninu awọn iṣẹ iranṣẹ ti Ifihan 14.

Nigba ti a ba pari iṣẹ yii, awọn atẹle Kristi a ti wa ni imuratan fun ifarahan Rẹ. "Nigba naa ni inu Oluwa yoo dun si ọrẹ Juda ati ti Jerusalẹmu, gẹgẹ bi o ti wa ni awọn ọjọ ogbó wa, ati ni awọn ọdun atẹyinwa." Malaki 3:4. Nigba naa ni ijọ ti Oluwa yoo gba fun ara Rẹ ni igba wiwa Rẹ yoo jẹ "ijọ ologo ti ko ni abawọn, tabi aleebu, tabi iru nnkan bawọni." Efesu 5:27. Nigba naa ni yoo tan bi owurọ, yoo

ni ẹwa bi oṣupa, yoo mọ bi oorun, yoo si ni ẹru bi ẹgbẹgun pẹlu ọpagun." Orin Solomoni 6:10.

Ni afikun si wiwa Oluwa sinu tẹmpili Rẹ, Malaki tun sọtẹlẹ nipa ipadabọ lẹẹkeji, wiwa Rẹ lati ṣe idajọ bayii: "Emi yoo si sun mọ yin fun idajọ, emi yoo si ṣe ẹlẹri yiyara si awọn oṣó, ati si awọn panṣaga, ati si awọn abura eke, ẹni ti n ni alagbaṣe lara ninu owo ọya re, ati opó ati alainibaba, ati si ẹni ti n rẹ alejo jẹ, ti wọn ko si bẹru Mi, ni Oluwa awọn ọmọ ogun wi." Malaki 3:5. Juda sọ nipa iṣẹlẹ kan naa nigba ti o wipe, "Kiyesi, Oluwa n bọ wa pẹlu ẹgbẹẹgbẹrun awọn eniyan mimọ Rẹ, lati ṣe idajọ gbogbo eniyan, ati lati da awọn alaiwabiọlọrun laarin wọn lẹbi nitori awọn iwa alaiwabiọlọrun wọn." Juda 14, 15. Wiwa yii, ati wiwa Oluwa sinu tẹmpili Rẹ, jẹ iṣẹlẹ ti wọn yatọ si ara wọn patapata.

Wiwa Kristi gẹgẹ bi olu alufa si inu ibi mimọ julọ, fun fifọ ibi mimọ mọ ti a sọ ninu Danieli 8:14, wiwa Ọmọ eniyan si ọdọ Arugbo Ọjọ, bi a ti ṣe alaye rẹ ninu Danieli 7:13, ati wiwa Oluwa sinu tẹmpili Rẹ, ti Malaki ṣe asọtẹlẹ rẹ jẹ alaye iṣẹlẹ kan naa; eyi pẹlu ni a ṣe afihan rẹ pẹlu wiwa ọkọ iyawo si ibi igbeyawo, ti Kristi ṣe alaye ninu owe awọn wundia mẹwa ti Matiu 25.

Ni igba ẹrun ati igba ikore 1844, a ṣe ikede, "Kristi Ọkọ iyawo n bọ." Nigba naa ni awọn ẹgbẹ mejeeji ti a ṣe afihan wọn pẹlu wundia ọlọgbọn ati alaigbọn dide—ẹgbẹ kan ti n fi ayọ wọna fun wiwa Oluwa, to si n fi tọkantọkan mura silẹ lati pade Rẹ; ati ẹgbẹ miran ti o wuwa nitori ibẹru, ti o n ṣe ipinu laimọ ohun ti a n sọ, wọn jẹ ki agbekalẹ otitọ o tẹ wọn lọrun, ṣugbọn wọn ko ni oore ọfẹ Ọlọrun. Ninu owe naa, nigba ti ọkọ iyawo de, "awọn ti wọn wa ni imuratan lọ pẹlu rẹ si ibi igbeyawo." Nibi a ri wipe wiwa ọkọ iyawo ṣaaju eto igbeyawo. Igbeyawo duro fun gbigba ti Kristi gba ijọba Rẹ. Ilu mimọ naa, Jerusalẹmu Tuntun, ti o jẹ olu ilu ati aṣoju ijọba naa, ni a pe ni "iyawo, iyawo Ọdọ Aguntan." Angẹli naa sọ fun Johanu wipe: "Maa bọ nibi, emi yoo fi iyawo Ọdọ Aguntan naa han ọ." Woli naa sọ pe "O gbe mi lọ ninu ẹmi, o si fi ilu nla naa han mi, Jerusalẹmu mimọ ti o n sọkalẹ wa lati ọdọ Ọlọrun." Ifihan 21:9, 10. O han gbangba wipe iyawo naa duro fun Ilu Mimọ naa, awọn wundia ti wọn lọ pade ọkọ iyawo si duro fun ijọ. Ninu Ifihan a sọ wipe awọn eniyan Ọlọrun jẹ alejo nibi ase igbeyawo. Ifihan 19:9. Bi wọn ba jẹ alejo, a ko le fi iyawo ṣe akajuwe wọn. Bi woli Danieli ti sọ, Kristi yoo gba, "agbara, ati ogo, ati ijọba" lọwọ Arugbo Ọjọ ni ọrun; yoo gba Jerusalẹmu Tuntun, olu ilu ijọba Rẹ, "ti a pese gẹgẹ bi iyawo ti a ṣe lọṣọ fun ọkọ rẹ." Danieli 7:14; Ifihan 21:2. Lẹyin ti O ba gba ijọba naa tan, yoo wa ninu ogo Rẹ, gẹgẹ bi Ọba awọn ọba ati Oluwa awọn oluwa, fun irapada awọn

eniyan Rẹ, ti yoo “joko pẹlu Abrahamu, ati Isaaki ati Jakọbu,” ni ori tabili Rẹ ninu ijọba Rẹ (Matiu 8:11; Luku 22:30), lati kopa ninu onjẹ alẹ ti igbeyawo Ọdọ Aguntan.

Ikede wipe, “Wo o Ọkọ iyawo n bọ wa” ni igba ẹrun 1844, mu ki ọpọ eniyan o reti wiwa Oluwa lọgan. Ni akoko ti a yan Ọkọ iyawo wa, ki i ṣe sinu aye, bi awọn eniyan ti n reti, ṣugbọn lọ si ọdọ Arugbo Ọjọ ni ọrun, lọ si ibi igbeyawo, gbigba ijọba Rẹ. “Awọn ti wọn ṣetan wọle pẹlu Rẹ lọ si ibi igbeyawo: a si ti ilẹkun.” Wọn ki yoo wa nibi igbeyawo naa ni ti ara; nitori ti yoo waye ni ọrun, nigba ti awọn wa lori ilẹ aye. Awọn atẹle Kristi nilati “duro de Oluwa wọn, nigba ti yoo ba pada de lati ibi igbeyawo.” Luku 12:36. Ṣugbọn wọn nilati ni oye iṣẹ Rẹ, ki wọn si fi igbagbọ tẹle bi O ti n wọle siwaju Ọlọrun. Ni ọna yii ni a fi le sọ wipe wọn lọ si ibi igbeyawo.

Ninu owe naa awọn ti wọn ni epo sinu kolobo wọn pẹlu fitila wọn ni wọn wọle si ibi igbeyawo. Awọn ti wọn ni imọ otitọ lati inu Iwe Mimọ, ti wọn tun ni Ẹmi ati oore ọfẹ Ọlọrun, ti wọn si fi suuru duro, ti wọn n wa Bibeli fun imọlẹ ti o mọlẹ si ni aṣalẹ idanwo kikoro—awọn wọnyi ri otitọ nipa ibi mimọ ni ọrun, ati bi Olugbala ti yipada ninu iṣẹ iranṣẹ Rẹ, pẹlu igbagbọ wọn tẹle ninu iṣẹ Rẹ ni ibi mimọ loke. Gbogbo awọn ti wọn gba otitọ kan naa latari ẹri Iwe Mimọ, n tẹle Kristi nipa igbagbọ bi O ti n wọle siwaju Ọlọrun lati ṣe iṣẹ ibalaja ti o kẹyin, ati ni opin rẹ, yoo gba ijọba Rẹ—gbogbo awọn wọnyi ni a ṣe afihan wọn wipe wọn wọle si ibi igbeyawo.

Ninu owe Matiu 22 akawe ti igbeyawo kan naa ni a lo, a si fihan kedere wipe idajọ iyẹniwo waye ṣaaju igbeyawo. Ṣaaju ki igbeyawo to ṣẹlẹ, ọba wa lati wa wo awọn alejo, lati ri boya gbogbo wọn ni wọn wọ aṣọ igbeyawo, aṣọ iwa mimọ ti a fọ, ti a sọ di funfun ninu ẹjẹ Ọdọ Aguntan. Matiu 22:11; Ifihan 7:14. A sọ ẹni ti ko kun oju oṣuwọn sita, ṣugbọn gbogbo awọn ti a ri wipe wọn wọ aṣọ igbeyawo lẹyin ti a yẹ wọn wo ni Ọlọrun gba ti a si ka wọn yẹ lati ni ipin ninu ijọba Rẹ ati lati joko lori itẹ Rẹ. Iṣẹ yiye iwa wo yii, ti mímọ awọn ti a pese silẹ fun ijọba Ọlọrun, ni i ṣe idajọ iyẹwewo, iṣẹ aṣekagba ninu ibi mimọ loke.

Nigba ti iṣẹ iyẹwewo ba pari, nigba ti a ba ti ṣe ayẹwo, ti a si ṣe idajọ gbogbo awọn ti wọn sọ wipe wọn jẹ atẹle Kristi ni gbogbo akoko, nigba naa ni akoko oore ọfẹ yoo pari, ilẹkun aanu yoo si ti. Bayi ni akotan, “Awọn ti wọn ṣetan ba wọle sinu ibi igbeyawo: a si ti ilẹkun,” a fi iṣẹ iranṣẹ Olugbala titi de akoko ikẹyin han wa titi fi di akoko ti a o pari iṣẹ nla fun igbala eniyan.

Ninu isin ibi mimọ ti aye yii, eyi ti, gẹgẹ bi a ti ri, jẹ apẹẹrẹ isin ninu ibi mimọ ti ọrun, nigba ti olu alufa ni Ọjọ Iwẹnumọ ba wọ inu ibi mimọ julọ, iṣẹ iranṣẹ ninu yara akọkọ a pari. Ọlọrun paṣẹ pe: “Ẹnikẹni

ko gbọdọ si ninu agọ ajọ nigba ti a ba wọle lati ṣe iwẹnumọ ninu ibi mimọ, titi ti yoo fi jade." Lefitiku 16:17. Nitori naa nigba ti Kristi wọ ibi mimọ julọ lati ṣe iṣẹ aṣekagba ti iwẹnumọ, O pari iṣẹ iranṣẹ ninu yara akọkọ. Ṣugbọn nigba ti iṣẹ iranṣẹ ninu yara akọkọ ba pari, iṣẹ iranṣẹ ninu yara keji a bẹrẹ. Ninu iṣẹ apẹẹrẹ, nigba ti olu alufa ba kuro ni ibi mimọ ni Ọjọ Iwẹnumọ, yoo lọ siwaju Ọlọrun pẹlu ẹjẹ ẹbọ ẹṣẹ fun awọn ọmọ Israeli ti wọn ronupiwada fun ẹṣẹ wọn nitootọ. Bẹẹ gẹgẹ Kristi ṣẹṣẹ pari abala kan ninu iṣẹ Rẹ gẹgẹ bi alagbawi wa ni, lati le bẹrẹ abala miran ninu iṣẹ Rẹ, O si n fi ẹjẹ Rẹ bẹbẹ niwaju Baba nitori ẹlẹṣẹ.

Koko ọrọ yii ko ye awọn Onireti ni 1844. Nigba ti akoko ti a n reti Olugbala kọja, wọn si gbagbọ wipe wiwa Rẹ sunmọ etile; wọn gba wipe wọn de ibi iṣoro nla, ati wipe iṣẹ Kristi gẹgẹ bi alagbawi wọn niwaju Baba ti pari. Wọn ri wipe a kọni ninu Bibeli wipe akoko oore ọfẹ fun eniyan yoo pari ni akoko diẹ ṣaaju wiwa Oluwa ninu ikuuku awọsanma. Eyi fi ara han lati inu ẹṣẹ Iwe Mimọ ti wọn tọka si akoko ti awọn eniyan a wa kiri, ti wọn a kan lẹkun, ti wọn a kigbe ni ẹnu ọna aanu, ti ki yoo si ṣi. Wọn wa n ro wipe boya akoko ti wọn n reti wiwa Kristi ni yoo jẹ ibẹrẹ akoko ti yoo wa ṣaaju wiwa Rẹ. Lẹyin ti wọn ti ṣe ikilọ nipa idajọ ti o sunmọ tosi, wọn ro wipe iṣẹ wọn fun araye ti pari, wọn si padanu ifẹ wọn fun igbala awọn ẹlẹṣẹ, wọn tun ri isọrọ- odi pẹlu igboya awọn alaiwabiọlọrun gẹgẹ bi idi miran lati gbagbọ wipe a ti gba Ẹmi Ọlọrun kuro lọdọ awọn ti wọn ti kọ aanu Rẹ silẹ. Gbogbo awọn nnkan wọnyi tubọ mu ki wọn gbagbọ wipe akoko oore ọfẹ ti pari, tabi, bi wọn ti sọ nigba naa, "a ti ti ilẹkun aanu."

Ṣugbọn imọlẹ ti o han kedere si wa pẹlu ayẹwo koko ọrọ ibi mimọ. Wọn ri wipe wọn tọna lati gbagbọ wipe opin 2300 ọjọ ní 1844 sami si iṣoro nla. Ṣugbọn nigba ti o jẹ otitọ wipe ilẹkun ireti ati ti aanu nipasẹ eyi ti awọn eniyan fi ri aaye si ọdọ Ọlọrun fun 1800 ọdun ti tì, ilẹkun miran ṣi silẹ, a fun awọn eniyan ni idariji ẹṣẹ nipasẹ iṣẹ ẹbẹ Kristi ni ibi mimọ julọ. Abala kan ninu iṣẹ iranṣẹ Re ti pari, ṣugbọn o jẹ ki omiran o bẹrẹ ni. Ilẹkun miran wa ṣí silẹ wọ inu ibi mimọ ni ọrun, nibi ti Kristi ti n ṣiṣẹ nitori ẹlẹṣẹ.

Ni bayii, a wa ri itumọ awọn ọrọ Kristi ninu Ifihan, ti o sọ fun ijọ ni akoko yii gan wipe: "Awọn nkan wọnyi ni Ẹni ti o jẹ mimọ, ti i ṣe otitọ, ti O ni kọkọrọ Dafidi, Ẹni ti O ṣi, ti ẹnikẹni ko le tì; ti O tì, ti ẹnikẹni ko le ṣi wí; Emi mọ iṣẹ rẹ: kiyesi Mo gbe ilẹkun ti a ṣi silẹ siwaju rẹ, ti ẹnikẹni ko le ti." Ifihan 3:7, 8.

Awọn ti wọn tẹle Kristi ninu iṣẹ nla iwẹnumọ nipa igbagbọ ni yoo gba anfani ibalaja Rẹ fun wọn, nigba ti awọn ti wọn kọ imọlẹ ti o ṣe alaye iṣẹ iranṣẹ yii silẹ ki yoo ri ibukun rẹ. Awọn Ju ti wọn kọ imọlẹ ti a

fifun wọn ni igba wiwa Kristi ni akọkọ sile, ti wọn kọ lati gbagbọ ninu Rẹ gẹgẹ bi Olugbala araye, ko le ri idariji ẹṣẹ nipa Rẹ. Nigbati Kristi goke lọ si ọrun, O wọ inu ibi mimọ lọ pẹlu ẹjẹ ara Rẹ lati tan ibukun igbala Rẹ si ori awọn ọmọ ẹyin Rẹ, a fi awọn Ju silẹ ninu okunkun biribiri lati tẹsiwaju ninu ẹbọ ati ọrẹ wọn, eyi ti ko ni itumọ. Iṣẹ iranṣẹ apẹẹrẹ ati ojiji ti pari. Ilẹkun yẹn, nibi ti awọn eniyan ti ri aaye wa si ọdọ Ọlọrun tẹlẹ ko le ṣi mọ. Awọn Ju kọ lati wa ni ọna kan ṣoṣo ti wọn fi le ri, nipasẹ iṣẹ iranṣẹ Rẹ ninu ibi mimọ ni ọrun. Nitori naa, wọn ko ni ibaṣepọ pẹlu Ọlọrun. A ti ti ilẹkun naa mọ wọn. Wọn ko ni oye Kristi gẹgẹ bi ẹbọ tootọ ati olubalaja kan ṣoṣo niwaju Ọlọrun; nitori naa wọn ko le gba ibukun iṣẹ igbala Rẹ.

Ipo ti awọn Ju ti wọn jẹ alaigbagbọ wa ṣe apejuwe ipo ti awọn alaibikita ati alaigbagbọ laarin awọn Kristẹni wa, awọn ti wọn mọọmọ jẹ alaimọkan nipa iṣẹ Olu Alufa alaanu wa. Ninu isin ti apẹẹrẹ, nigba ti olu alufa ba wọ inu ibi mimọ julọ, gbogbo Israeli ni yoo pejọ pọ yi ibi mimọ ka, wọn a si fi tọwọtọwọ rẹ ọkan wọn silẹ niwaju Ọlọrun, ki wọn baa le gba idariji fun ẹṣẹ wọn ati ki a ma baa ge wọn kuro ninu ijọ. Bawo ni o ti ṣe pataki to ninu amuṣẹ apẹẹrẹ Ọjọ Iwẹnumọ lati ni oye iṣẹ Olu Alufa wa, ki a si mọ ojuṣe ti a n fẹ lati ọdọ wa.

Awọn eniyan ko le maa kọ ikilọ ti Ọlọrun ran si wọn ninu aanu silẹ laijiya. A ran iṣẹ iranṣẹ lati ọrun si araye ni akoko Noah, igbala wọn si duro lori bi wọn ba ti ṣe dahun si iṣẹ iranṣẹ naa. Nitori ti wọn kọ ikilọ naa silẹ, a mu Ẹmi Ọlọrun kuro lọdọ iran ẹlẹṣẹ, wọn si ṣegbe sinu Ikun Omi. Ni akoko Abrahamu, aanu kọ lati bẹbẹ fun awọn ti wọn jẹbi ninu awọn olugbe Sodomu, gbogbo wọn ayafi Lọti pẹlu iyawo ati awọn ọmọbinrin rẹ meji ni wọn ṣegbe ninu ina ti a ran lati ọrun. Bẹẹ gẹgẹ ni o ri ni awọn akoko Kristi. Ọmọ Ọlọrun sọ fun awọn Ju alaigbagbọ ni akoko naa pe: "A fi ile yin silẹ fun yin ni isọdahoro" Matiu 23:38. Ni wiwo sun un dé igba ikẹyin, Agbara ayeraye kan naa sọ nipa awọn ti wọn "ko gba ifẹ fun otitọ, ki a baa le gba wọn la:" "Nitori idi eyi Ọlọrun yoo ran itanjẹ ti o lagbara si wọn, ki wọn baa le gba irọ gbọ, ki gbogbo awọn ti ko gba otitọ gbọ ṣugbọn ti wọn ni inudidun ninu aiṣododo baa le di ẹni egbe." 2 Tẹsalonika 2:10—12. Bi wọn ti kọ awọn ikọni ọrọ Rẹ silẹ, Ọlọrun gba Ẹmi Rẹ, O si fi wọn silẹ pẹlu itanjẹ ti wọn yan.

Ṣugbọn Kristi ṣi n bẹbẹ nitori eniyan, a yoo si fi imọlẹ fun ẹnikẹni ti o ba wa. Bi o tilẹ jẹ wipe awọn Onireti ko kọkọ ni oye eyi, nikẹyin o han kedere si wọn bi Iwe Mimọ ti o ṣe alaye ipo ti wọn wa gan an ti n ṣi silẹ niwaju wọn.

Akoko idanwo nla ni o tẹle ikọja akoko ni 1844 fun awọn ti wọn ṣi ni igbagbọ ninu ipadabọ. Itunu kan ṣoṣo ti wọn ni, gẹgẹ bi o ti ni i ṣe

pẹlu ipo wọn nitootọ ni imọlẹ ti o dari ọkan wọn si ibi mimọ ni oke. Awọn miran kọ igbagbọ wọn silẹ ninu iṣọwọka akoko iṣọtẹlẹ ti wọn n lo tẹlẹ, wọn si sọ wipe agbara Satani tabi iṣẹ eniyan ni agbara Ẹmi Mimọ ti o tẹle ẹgbẹ ipadabọ. Awọn ẹgbẹ miran gbagbọ tọkantọkan wipe Oluwa ni O dari wọn ninu iriri wọn latẹyin wa; bi wọn si ti duro ti wọn n wọna ti wọn si n gbadura lati mọ ifẹ Ọlọrun, wọn ri wipe Olu Alufa nla wọn ti bẹrẹ iṣẹ iranṣẹ miran, ati ni titẹle pẹlu igbagbọ a dari wọn lati ri iṣẹ aṣekagba ti ijọ. Wọn ni oye ti o yè kooro si nipa iṣẹ iranṣẹ angẹli ikini ati ekeji, a si pese wọn silẹ lati gba ati lati fi ikilọ ẹlẹru ti iṣẹ iranṣẹ angẹli kẹta ti Ifihan 14 fun araye.

25

Ofin Ọlọrun Wa Titi Lae

"Aṣi tẹmpili Ọlọrun silẹ ni ọrun, a si ri apoti majẹmu ninu tẹmpili Rẹ." Ifihan 11:19. Apoti majẹmu Ọlọrun wa ninu ibi mimọ julọ, abala keji ninu ibi mimọ. Ninu iṣẹ iranṣẹ ninu ibi mimọ ni aye, eyi ti o duro "gẹgẹ bi apẹẹrẹ ati ojiji awọn ohun ti ọrun," ni Ọjọ nla ti Iwẹnumọ nikan ni a to ma a n ṣi yara yii lati lọ ṣe iwẹnumọ ibi mimọ. Nitori naa ikede wipe a ṣi tẹmpili Ọlọrun silẹ ni ọrun ati pe a ri apoti majẹmu Rẹ tọka si ṣiṣi ibi mimọ julọ ninu ibi mimọ ti ọrun silẹ ni 1844 bi Kristi ti wọ ibẹ lọ lati ṣe aṣekagba iṣẹ iwẹnumọ. Awọn ti wọn fi igbagbọ tẹle Olu Alufa nla wọn bi O ti bẹrẹ iṣẹ Rẹ ninu ibi mimọ julọ, ri apoti majẹmu Rẹ. Bi wọn ti kọ nipa koko ọrọ ibi mimọ, wọn ni oye iyipada ti o de ba iṣẹ iranṣẹ Olugbala, wọn si ri wipe O n ṣiṣẹ niwaju apoti majẹmu Ọlọrun, ti O n fi ẹjẹ Rẹ bẹbẹ nitori ẹlẹṣẹ.

Apoti ti o wa ninu agọ ti aye ní walaa okuta meji, nibi ti a kọ ilana ofin Ọlọrun si. Apoti naa jẹ ibi ti a fi walaa ofin pamọ si, awọn ilana Ọlọrun wọnyi jẹ ki o ṣe pataki, ati ki o si jẹ mimọ. Nigba ti a ṣi tẹmpili Ọlọrun silẹ ni ọrun, a ri apoti majẹmu. Ninu ibi mimọ julọ ninu ibi mimọ ni ọrun, a kọ ofin mimọ Ọlọrun sibẹ—ofin ti Ọlọrun sọ jade funra Rẹ laarin àrá ni Sinai ti O tun fi ika ara Rẹ kọ wọn si ori walaa okuta.

Ofin Ọlọrun ninu ibi mimọ ti ọrun ni ojulowo nla, eyi ti ilana ti a gbẹ si ori walaa okuta ti Mose kọ silẹ ninu Pẹntatiuku jẹ ẹda ti o peye. Gbogbo awọn ti wọn ni oye koko ọrọ pataki yii ni wọn ri wipe ofin Ọlọrun jẹ mimọ ati pe ko le yipada. Wọn ri bi ọrọ Olugbala ti lagbara to ni ọna ti wọn ko gba ri bẹẹ ri: "Titi ọrun ati aye yoo fi kọja lọ, kinkini ninu ofin ki yoo kọja lọ." Matiu 5:18. Ofin Ọlọrun, ti i ṣe ifihan ifẹ Rẹ,

ẹdakọ iwa Rẹ, gbọdọ wa titi lae, “gẹgẹ bi ẹlẹri otitọ ni ọrun.” Ko si aṣẹ kan ti a fagile; ko si kiun kan ti a yipada. Ọlọrun sọ wipe: “Titi lae Oluwa, a ti fi idi ọrọ Rẹ mulẹ ni ọrun.” “Gbogbo aṣẹ Rẹ ni wọn daju. Wọn duro titi lae ati laelae.” O. Dafidi 119:89; 111:7, 8.

Ni aarin gungun Ofin Mẹwa ni a kọ ofin kẹrin si, gẹgẹ bi a ti kọkọ kede rẹ; “Ranti ọjọ isinmi lati pa a mọ. Ọjọ mẹfa ni iwọ yoo ṣiṣẹ, ti iwọ yoo ṣe iṣẹ rẹ gbogbo: ṣugbọn ọjọ keje ni ọjọ isinmi Oluwa Ọlọrun rẹ: ninu rẹ ni iwọ ko gbọdọ ṣe iṣẹ kankan, iwọ, tabi ọmọkunrin rẹ, tabi ọmọbinrin rẹ, tabi ọmọ ọdọ rẹ ọkunrin tabi ọmọ ọdọ rẹ obinrin, tabi malu rẹ tabi ajeji ti n bẹ lẹnu ilẹkun rẹ: nitori ni ọjọ mẹfa ni Oluwa da ọrun ati aye, ati okun, ati ohun gbogbo ti n bẹ ninu wọn, O si sinmi ni ọjọ keje: nitori naa Oluwa bukun Ọjọ Isinmi, O si ya a si mimọ.” Eksodu 20:8—11.

Ẹmi Ọlọrun fi ọwọ ba ọkan awọn akẹkọ ọrọ Rẹ. A tẹ ẹ mọ wọn lọkan wipe wọn ti fi aimọkan ru ilana yii nipa ṣiṣe aibikita nipa ọjọ Isinmi Ẹlẹda. Wọn bẹrẹ si i wa idi fun pipa ọjọ kini ọsẹ mọ dipo ọjọ ti Ọlọrun ya sọtọ. Wọn ko le ri idi kan ninu Iwe Mimọ wipe a ti pa ofin kẹrin rẹ tabi wipe a ti yi ọjọ isinmi pada, a koi tii mu ibukun ti a ṣe si ori ọjọ keje kuro. Wọn ti n fi tọkantọkan wa lati mọ ati lati ṣe ifẹ Ọlọrun; ni bayi ti wọn ri ara wọn gẹgẹ bi arufin Rẹ, ibanujẹ kun ọkan wọn, wọn si fi igbọran wọn han si Ọlọrun nipa pipa ọjọ Isinmi mọ.

Ọpọ akitiyan ni a ṣe lati bi igbagbọ wọn lulẹ. Ko si ẹni ti ko ni ṣai ri wipe bi ibi mimọ ni aye ba jẹ apẹẹrẹ ti ọrun, ofin ti a fi sinu apoti ni aye yoo jẹ ẹda gan ti ofin ti o wa ni ọrun; ati pe gbigba otitọ nipa ibi mimọ ni ọrun kan gbigba aṣẹ ofin Ọlọrun ati ojuṣe ọjọ Isinmi ti ofin kẹrin. Eyi ni aṣiri bi a ti ṣe atako kikoro si alaye Iwe Mimọ nipa ọna ti o wa ni irẹpọ lati ṣe alaye iṣẹ iranṣẹ Kristi ninu ibi mimọ ti ọrun. Awọn eniyan n wọna lati ti ilẹkun ti Ọlọrun ṣi silẹ, ati lati ṣi ilẹkun ti O ti tì. Ṣugbọn “Ẹni ti O ṣi, ti ẹnikẹni ko le ti, ti O ti ti ẹnikẹni ko le ṣi,” ti sọ pe: “Kiyesi, mo ti gbe ilẹkun ti a ṣi ka iwaju rẹ, ti ẹnikẹni ko le ti.” Ifihan 3:7, 8. Kristi ti ṣi ilẹkun naa, tabi iṣẹ iranṣẹ, ti ibi mimo julọ silẹ, imọlẹ n tan lati ibi ilẹkun ibi mimọ ti a ṣi silẹ ni ọrun, a si fihan wipe ofin kẹrin wa ninu awọn ofin ti a kọ sibẹ; ohun ti Ọlọrun ti fi idi rẹ mulẹ, ko si ẹni ti o le bi i wo.

Awọn kan ti wọn gba imọlẹ nipa ibalaja Kristi ati wipe ofin Ọlọrun wa titi lae ri wipe awọn otitọ wọnyi wa ninu Ifihan 14. Awọn iṣẹ iranṣẹ ori iwe yii ni ikilọ mẹta ti yoo pese awọn olugbe aye silẹ fun wiwa Oluwa lẹẹkeji. Ikede wipe, “Wakati idajọ Rẹ de,” tọka si iṣẹ aṣekagba ti iṣe iranṣẹ Kristi fun igbala eniyan. O kede otitọ ti a nilati kede titi ti Olugbala a fi pari ẹbẹ Rẹ ti yoo si pada wa sinu aye lati ko awọn eniyan Rẹ lọ si ọdọ ara Rẹ. Iṣẹ idajọ ti o bẹrẹ ni 1844 yoo tẹsiwaju titi

ti a o fi ṣe ipinu lori gbogbo ọrọ, ati ti alàáyè ati ti oku; nitori naa yoo tẹsiwaju titi fi di opin akoko oore ọfẹ fun eniyan. Ki eniyan baa le wa ni imurasilẹ lati le duro ni ọjọ idajọ, iṣẹ iranṣẹ naa pa wọn lase lati "bẹru Ọlọrun, ki wọn si fi ogo fun," "ki wọn si jọsin Ẹni ti O da ọrun, ati aye, ati okun ati awọn orisun omi." Abayọri gbigba awọn iṣẹ iranṣẹ wọnyi ni a funni pẹlu ọrọ yii: "Iwọnyi ni awọn ti n pa ofin Ọlọrun mọ ati igbagbọ Jesu." Lati le mura silẹ fun ọjọ idajọ, o ṣe pataki ki awọn eniyan pa ofin Ọlọrun mọ. Ofin naa ni yoo jẹ odiwọn fun iwuwasi ni idajọ. Apostoli Pọlu sọ wipe: "Iye awọn ti wọn ṣe ninu ofin ni a o fi ofin da lẹjọ, . . . ni ọjọ ti Ọlọrun yoo ṣe idajọ aṣiri awọn eniyan nipasẹ Jesu Kristi." O tun sọ wipe "awọn oluṣe ofin ni a o da lare." Romu 2:12—16. Igbagbọ se pataki lati le pa ofin Ọlọrun mọ; nitori laisi igbagbọ ko ṣe e ṣe lati wu u." Ati pe "ohunkohun ti ko ba i ṣe ti igbagbọ, ẹṣẹ ni." Heberu 11:6; Romu 14:23.

Nipasẹ angẹli akọkọ, a pe awọn eniyan lati "bẹru Ọlọrun ki wọn si fi ogo fun" ki wọn si jọsin Rẹ gẹgẹ bi Ẹlẹda ọrun ati aye. Lati le ṣe eyi wọn nilati ṣe igbọran si ofin Rẹ. Ọlọgbon nì sọ wipe: "Bẹru Ọlọrun ki ẹ si pa ofin Rẹ mọ: nitori eyi ni gbogbo ojuṣe eniyan." Oniwasu 12:13. Laisi igbọran si ofin Rẹ, ko si ijọsin ti o le dun mọ Ọlọrun ninu. "Eyi ni ifẹ Ọlọrun wipe a pa ofin Rẹ mọ." "Ẹnikẹni ti o ba yi eti rẹ kuro ninu gbigbọ ofin, ani adura rẹ yoo jẹ ohun irira." 1 Johanu 5:3; Owe 28:9.

Ojuṣe lati jọsin Ọlọrun duro lori koko ọrọ wipe Oun ni Ẹlẹda ati wipe awọn ẹda yoku wa laaye nipasẹ Rẹ. Nibikibi ti O ba ti sọ wipe Oun yẹ fun ijọsin ati ibọwọfun ju awọn ọlọrun keferi lọ ninu Bibeli, O maa n sọ nipa ẹri agbara atida Rẹ. "Ère ni gbogbo awọn Ọlọrun orilẹ ede: ṣugbọn Oluwa ni O da awọn ọrun." O. Dafidi 96:5. "Tani ẹyin i ba wa fi Mi we, tabi tani o ba Mi dọgba? ni Ẹni Mimọ wi. Ẹ gbe oju yin soke, ki ẹ si wo, tani o da awọn nnkan wọnyi." "Bayi ni Oluwa ti O da awọn ọrun wi, Ọlọrun funra Rẹ ti O da aye ti o si ṣe e: . . . Emi ni Oluwa; ko si si ẹlomiran." Aisaya 40:25, 26; 45:18. Olorin sọ wipe: "Ẹ mọ wipe Oluwa Oun ni Ọlọrun: Oun ni O da wa, ki i si i ṣe awa funra wa." "Ẹ wa, ẹ jẹ ki a jọsin, ki a tẹriba: ẹ jẹ ki a kunlẹ niwaju Oluwa Ẹlẹda wa." O. Dafidi 100:3; 95:6. Awọn ẹda mimọ ti wọn n jọsin Ọlọrun ni ọrun sọ, gẹgẹ bi idi ti wọn fi n sin wipe: "Iwọ ni o yẹ Oluwa lati gba ogo, ati ọla, ati agbara: nitori Iwọ ni o da ohun gbogbo." Ifihan 4:11.

Ni Ifihan 14, a pe awọn eniyan lati jọsin Ẹlẹda; asọtẹlẹ naa si ṣe afihan ẹgbẹ kan ti n pa ofin Ọlọrun mọ nitori iṣẹ iranṣẹ onipele mẹta naa. Ọkan ninu awọn ofin yii tọka taara si Ọlọrun gẹgẹ bi Ẹlẹda. Ilana kẹrin sọ wipe: "Ọjọ keje ni ọjọ Isinmi Oluwa Ọlọrun rẹ: . . . nitori ni ọjọ mẹfa ni Ọlọrun da ọrun ati aye, okun ati ohun gbogbo ti o wa ninu wọn, O si sinmi ni ọjọ keje: nitori naa Oluwa bukun ọjọ Isinmi, O si ya

a si mimọ.” Eksodu 20:10, 11. Nipa ọjọ isinmi, Oluwa tẹsiwaju lati sọ wipe, o jẹ “ami, . . . ki ẹyin baa le mọ wipe Emi ni Oluwa Ọlọrun yin.” Isikiẹli 20:20. Idi rẹ si ni wipe: “Nitori ni ọjọ mẹfa ni Oluwa da ọrun ati aye, O sinmi ni ọjọ keje, O si tura.” Eksodu 31:17.

“Pataki ọjọ isinmi gẹgẹ bi iranti iṣẹ dida ni wipe ni gbogbo igba ni o n sọ fun wa idi tootọ ti ijọsin fi yẹ fun Ọlọrun”—nitori pe Oun ni Ẹlẹda, awa si ni ẹda Rẹ. “Nitori naa ọjọ isinmi jẹ ipilẹ fun ijọsin Ọlọrun, nitori ti o fi otitọ nla yii kọni ni ọna ti o lọwọ, ko si si agbekalẹ miran ti o ṣe eyi. Idi tootọ fun ijọsin Ọlọrun, ki i ṣe ni ọjọ keje lasan, ṣugbọn fun gbogbo ijọsin ni a ri ninu iyatọ ti o wa laarin Ẹlẹda ati ẹda Rẹ. Otitọ nla yii ko le parẹ laelae, a ko si gbọdọ gbagbe rẹ.” Ọlọrun fi Isinmi lelẹ ninu Edẹni lati le jẹ ki otitọ yii o le maa wa ninu ọkan gbogbo eniyan; niwọn igba ti bi O ti jẹ Ẹlẹda wa ba si jẹ idi fun wa lati sin In, bẹẹ naa ni ọjọ Isinmi yoo tẹsiwaju lati jẹ ami ati ohun iranti. Bi o ba ṣe wipe gbogbo aye ni o n pa ọjọ Isinmi mọ ni, ero ati ifẹ eniyan i ba lọ si ọdọ Ẹlẹda gẹgẹ bi Ẹni ti o yẹ fun ijọsin, bẹẹ si ni ki ba ti si aborișa, alaigbagbọ ninu iwalaaye Ọlọrun tabi alaigbagbọ. Pipa ọjọ isinmi mọ jẹ ami igbọran si Ọlọrun tootọ, “Ẹni ti O da ọrun ati aye ati okun ati awọn orisun omi.” O tọna wipe iṣẹ iranṣẹ ti o pa eniyan laṣẹ lati sin Ọlọrun, ti o tun sọ wipe ki wọn pa ofin Rẹ mọ yoo pe wọn lati pa ofin kẹrin mọ.

Ni iyatọ si awọn ti wọn pa ofin Ọlọrun mọ, ti wọn tun ni igbagbọ Jesu, angẹli kẹta tọka si ẹgbẹ miran, eyi ti a ṣe ikilọ ọlọwọ ti o si banilẹru fun aṣiṣe wọn: “Bi ẹnikẹni ba jọsin ẹranko naa ati aworan rẹ, ti o si gba ami rẹ siwaju ori rẹ, tabi si ọwọ rẹ, oun pẹlu yoo mu ninu waini ibinu Ọlọrun.” Ifihan 14:9, 10. Itumọ ti o tọna fun awọn ami ti a lo ṣe pataki lati le ni oye iṣẹ iranṣẹ yii. Kini a fi ẹranko, aworan ati ami ṣe apejuwe?

Abala asọtẹlẹ ti a ti lo awọn ami yii bẹrẹ pẹlu Ifihan 12, pẹlu dragoni ti o n wa lati pa Kristi nigba ti a bi. A sọ wipe Satani ni dragoni naa (Ifihan 12:9), oun ni o mi si Hẹrodu lati pa Olugbala. Ṣugbọn aṣoju nla fun Satani lati ba Kristi ati awọn eniyan Rẹ jagun ni ọrundun akọkọ ni akoko Kristẹni ni ijọba Romu, ninu eyi ti ẹsin ibọrișa fi ẹsẹ mulẹ. Nitori naa, nigba ti dragoni naa kọkọ duro fun Satani, ni idakeji ẹwẹ, o duro fun ijọba Romu aborișa.

Ni ori kẹtala (ẹsẹ 1—10) a ṣe alaye ẹranko miran, “ti o dabi amọtẹkun,” eyi ti dragoni naa fun ni “agbara rẹ, ati ibujoko rẹ, ati aṣẹ nla.” Ami yii, bi ọpọ awọn Protestant ti ṣe gbagbọ, duro fun ijọ padi, eyi ti o gba agbara ati ibujoko ati aṣẹ ti ijọba Romu igbaani fi igba kan ni. A sọ nipa ẹranko ti o dabi amọtẹkun nì pe: “A fun ni ẹnu ti o n sọ awọn ohun nla ati ọrọ odi. . . . O si la ẹnu rẹ ni sisọ ọrọ odi si Ọlọrun, lati sọ

ọrọ odi si orukọ Rẹ, ati agọ Rẹ, ati awọn ti n gbe ni ọrun. A si fifun lati ba awọn eniyan mimọ jagun, ati lati ṣẹgun wọn: a si fi agbara fun lori gbogbo ẹya ati ede ati orilẹ ede." Asọtẹlẹ yii, eyi ti o fẹrẹ ba alaye iwo kekere ti Danieli 7 mu patapata, laijiyan tọka si ijọ padi.

"A fun ni agbara lati tẹsiwaju fun ogoji oṣu le meji." Woli naa sọ pe, "Mo ri ọkan ninu awọn ori rẹ bi ẹnipe a ṣa a pa." Ati pe, "Ẹni ti o ba koni ni igbekun yoo lọ si igbekun: ẹni ti o ba fi ida pani ni a yoo fi ida pa." Ogoji oṣu le meji jẹ nnkankan naa pẹlu "akoko ati awọn akoko ati idaji akoko," ọdun mẹta aabọ, tabi 1260 ọjọ ti Danieli 7—akoko ti agbara ijọ padi yoo ni awọn eniyan Ọlọrun lara. Akoko yii, bi a ti sọ ni awọn apa iṣaaju, bẹrẹ pẹlu iṣakoso ijọ padi ni 538, o si dopin ni 1798. Ni akoko naa awọn ẹgbẹgun France mu popu ni igbekun, agbara ijọ padi gba ọgbẹ aṣapa rẹ, a si mu asọtẹlẹ naa ṣẹ wipe, "Ẹni ti n muni ni igbekun yoo lọ si igbekun."

Nibi a funni ni ami miran. Woli naa sọ pe: "Mo si wo o ẹranko miran jade wa lati inu ilẹ; o ni iwo meji bi ti ọdọ aguntan." Ẹsẹ 11. Ifarahan ẹranko yii ati ọna ti o gba dide fihan wipe orilẹ ede ti o duro fun yatọ si awọn ti a fi ami tẹlẹ ṣe apejuwe. Awọn ijọba nla ti wọn ṣe akoso aye ni a ṣe afihan wọn fun Danieli gẹgẹ bi ẹranko ti n jẹ ẹran, ti wọn n dide nigba ti "afẹfẹ mẹrẹẹrin ọrun ba fẹ lori okun nla." Danieli 7:2. Ninu Ifihan 17 angẹli kan ṣe alaye wipe omi duro fun "awọn eniyan, ati ọpọ eniyan, ati orilẹ ede, ati ede." Ifihan 17:15. Afẹfẹ duro fun wahala. Afẹfẹ mẹrin ọrun ti n fẹ lori okun nla tumọ si iṣẹlẹ ti o banilẹru ti iṣẹgun ati idoju ijọba bolẹ nipasẹ eyi ti awọn ijọba fi de ipo agbara.

Ṣugbọn ẹranko ti o ni iwo bi ọdọ aguntan ni a ri "ti o n jade wa lati inu ilẹ." Dipo bíbi agbara miran wó lati fi idi ara rẹ mulẹ, orilẹ ede ti a ṣe afihan rẹ bayii gbọdọ dide nibi ti eniyan ko gbe ri, ki o si dagba diẹdiẹ pẹlu alaafia. Nitori naa, ko le dide laarin awọn orilẹ ede Europe ti wọn n jijakadi laarin ara wọn—okun onirudurudu ti "awọn eniyan, ati ọpọ eniyan, ati orilẹ ede ati ede." A nilati ri laarin awọn orilẹ ede ti wọn wa ni iha iwọ oorun.

Orilẹ ede wo, ni Ilẹ Tuntun, ni o n di alagbara ni 1798, ti o n ni irisi agbara ati titobi, ti o si n ri afiyesi araye? Itumọ ami naa ko nilo ibeere. Orilẹ ede kan ṣoṣo ni asọtẹlẹ yii ba mu; laiṣe aniani, o tọka si United States ti Amẹrika. Lati igba de igba ero, ti o fẹrẹ dọgba tan pẹlu ọrọ onkọwe mimọ ni awọn ṣọrọṣọrọ ati opitan ti lo laimọ, ni ṣiṣe alaye bi orilẹ ede yii ti dide ati idagbasoke rẹ. A ri ẹranko naa "ti o n goke lati inu ilẹ;" gẹgẹ bi awọn olutumọ ti sọ ọ, ọrọ ti a pe ni "goke wa" nibi tumọ si "didagba soke tabi riru bi eweko." Bi a si ti ri, orilẹ ede naa nilati dide nibi ti ero ko po si. Onkọwe gbajugbaja kan, nigba

ti o n ṣe alaye bi United States ti dide sọ nipa “aṣiri jijade rẹ lati inu ofifo,” o tun sọ wipe: “Bi eso ni idakẹrọrọ, o dagba di ijọba nla.” Iwe ilewọ ti ilẹ Europe kan ni 1850 sọ nipa United States gẹgẹ bi ijọba nla ti o jẹ agbayanu, ti o n “dide” ati laarin idakẹjẹ aye lojoojumọ o n fi kun agbara ati igberaga rẹ.” Edward Everett, ninu ọrọ nipa awọn Arinrinajo ti wọn tẹ ilu yii do sọ wipe: “Ṣe wọn wa ibi ti o farasin, ti ko ni wahala latari ifarasin rẹ, ti o ni aabo nitori ti o jinna rere, nibi ti ijọ kekere ti Leyden ti le jẹ anfani ominira ẹri ọkan? Kiyesi agbegbe nla nibi ti, pẹlu iṣẹgun pẹlu alaafia, wọn ti gbe ọpagun agbelebu!”

“O si ni iwo meji bi ọdọ aguntan.” Iwo bi ọdọ aguntan ṣe fihan wiwa ni ọdọ, alailẹṣẹ, suuru, eyi ti o ṣe alaye ni ręgi, iwa United States nigba ti a fihan woli naa nigba ti o n “goke wa” ni 1798. Laarin awọn Kristẹni ti a le kuro ni ilu ti wọn kọkọ sa wa si Amẹrika, ti wọn wa aabo kuro lọwọ ininilara ọba ati ainifarada awọn alufa ni ọpọlọpọ ti wọn pinu lati da ijọba silẹ lori ipilẹ nla ominira ti iṣelu ati ẹsin. Igbagbọ wọn wa ninu Ikede Ominira, eyi ti o ṣe alaye otitọ nla nì wipe, “gbogbo eniyan ni a da dọgba” ti a si fun wọn ni ẹtọ abínimọ si “iwalaaye, ominira ati wiwa idunnu.” Iwe ofin si gba awọn eniyan laaye si ẹtọ lati ṣe ijọba ara wọn, pẹlu wipe awọn aṣoju ti a yan sipo pẹlu ìbò ti o pọ julọ ni yoo ṣe ofin. A tun fun awọn eniyan ni ominira ti igbagbọ, a gba gbogbo eniyan laaye lati sin Ọlọrun gẹgẹ bi ẹri ọkan wọn ti sọ fun wọn. Aṣa ailọba ati ẹsin Protestant jẹ ipilẹ fun orilẹ ede naa. Awọn ipilẹ wọnyi si ni aṣiri agbara ati ibukun rẹ. Awọn ti a nilara ati awọn ti a jẹniya ni gbogbo ilẹ ti n ṣe ẹsin Kristẹni ni wọn yiju si ilẹ yii pẹlu ifẹ ọkan ati ireti. Ẹgbẹẹgbẹrun ni wọn wa si bèbè rẹ ti United States si goke de ibi ti o ni apẹẹrẹ laarin awọn orilẹ ede alagbara aye.

Ṣugbọn ẹranko ti o ni iwo bi ọdọ aguntan naa “sọrọ bi dragoni. O si lo gbogbo agbara ẹranko iṣaaju niwaju rẹ, o si mu ki aye ati awọn ti n gbe inu rẹ o jọsin ẹranko iṣaaju, eyi ti a ti wo ọgbẹ aṣapa rẹ san; . . . o n sọ fun awọn ti n gbe ori ilẹ aye wipe ki wọn o yá aworan fun ẹranko naa, ti o ni ọgbẹ ida ti o si yè.” Ifihan 13:11—14.

Iwo ti o dabi ti aguntan ati ohùn dragoni apejuwe naa tọka si iyatọ lọna ti o han kedere laarin ohun ti o sọ wipe oun jẹ ati iwuwasi orilẹ ede ti a ṣe afihan rẹ. “Iṣọwọsọrọ” awọn orilẹ ede ni iṣesi ile aṣofin ati aṣẹ eto idajọ rẹ. Nipa iwuwasi rẹ, ki yoo tẹle awọn agbekalẹ alaafia ati ominira ti o pe ni ipilẹ iṣofin rẹ. Asọtẹlẹ ti o wipe yoo sọrọ “bi dragoni” yoo si lo “gbogbo agbara ẹranko iṣaaju” sọtẹlẹ ni kedere idagbasoke ẹmi ainifarada ati inunibini ti awọn orilẹ ede ti a ṣe afihan wọn pẹlu dragoni ati ẹranko bi amọtẹkun naa fihan. Gbolohun wipe ẹranko naa ti o ni iwo meji “mu ki aye ati awọn ti n gbe inu rẹ o jọsin ẹranko

iṣaaju” fihan wipe a yoo lo aṣẹ orilẹ ede yii lati ṣe awọn ofin kan ti yoo jẹ igbọran si ofin ijọ padi.

Iru iwa bayi yoo jẹ atako taara si ẹkọ ipilẹ ijọba yii, si ọgbọn awọn agbekalẹ olominira rẹ, si ẹjẹ ọlọwọ ti Ikede Ominira ati si iwe ofin iṣejọba. Awọn ti wọn tẹ orilẹ ede yii do fi ọgbọn wa ọna lati maṣe lo agbara ijọba nitori ijọ, pẹlu abayọri rẹ ti a ko le fe ku—ainifarada ati inunibini. Iwe ofin iṣejọba sọ wipe: “Ile igbimọ aṣofin ko gbọdọ ṣe ofin nipa idasilẹ ẹsin, bẹẹ ni ko gbọdọ dí ẹnikẹni lọwọ nipa rẹ,” ati pe “a ko gbọdọ dan ẹnikẹni wo lori ẹsin ki o to le kun oju oṣuwọn fun ipo ilu ni United States.” Ayafi ni afojudi si awọn ohun aabo fun ominira orilẹ ede yii ni a fi le lo aṣẹ ilu lati mu ki ẹnikẹni o ṣe ojuṣe ẹsin kankan. Ṣugbọn aidọgba iru iwa yii ba apẹẹrẹ ti a fi ṣe alaye naa mu. Ẹranko ti o ni iwo bi ọdọ aguntan—ni ọrọ, o mọ, o ni suuru, ko le ṣeni ni jamba—ni o n sọrọ bi dragoni.

“O n sọ fun awọn ti n gbe ilẹ aye, pe ki wọn yá aworan fun ẹranko naa.” Nibi a ṣe afihan iṣọwọṣejọba eyi ti agbara ati iṣofin wa ni ọdọ awọn eniyan, ẹri ti o han daju wipe United States ni orilẹ ede ti asọtẹlẹ n sọ. Ṣugbọn kini “aworan ẹranko naa”? bawo si ni a yoo ṣe ṣe? Ẹranko oniwo meji ni o ya aworan naa, o si jẹ aworan si ẹranko naa. A tun pe e ni aworan ti ẹranko naa. Nitori naa lati mọ ohun ti aworan naa jẹ ati bi a yoo ti ṣe e, a nilati kọ nipa iwuwasi ẹranko naa funra rẹ—ijọ padi.

Nigba ti ijọ iṣaaju bajẹ nipa yiya kuro ninu otitọ iyinrere, ti o si gba awọn aṣa ati iṣesi ibọriṣa, o padanu Ẹmi ati agbara Ọlọrun; lati le dari ẹri ọkan awọn eniyan, o wa atilẹyin agbara aye. Ayọrisi rẹ ni ijọ padi, ijọ ti o n dari agbara ilu ti o si n lo o fun anfani ara rẹ, ni paapa julọ lati jẹ “ẹlẹkọ odi” niya. Ki United States to le yá aworan fun ẹranko naa, agbara ẹsin nilati ṣe akoso ijọba ilu debi pe ijọ yoo lo aṣe ilu pẹlu lati mu erongba ara rẹ ṣẹ.

Nibikibi ti ijọ ba ti gba agbara iṣelu, o maa n lo o lati jẹ awọn ti ko gba ohun kan naa gbọ pẹlu rẹ niya. Awọn ijọ Protestant ti wọn tẹle apẹẹrẹ Romu nipa fifọwọsọwọpọ pẹlu agbara aye ti fi iru ifẹ bakan naa han—lati maṣe faaye gba ominira ẹri ọkan. A ṣe apẹẹrẹ eyi ninu inunibini ọlọjọ gbọọrọ ti ijọ England ṣe si awọn ti wọn ko gba ohun kan naa gbọ pẹlu rẹ. Ni akoko ọrundun kẹrindinlogun ati ikẹtadinlogun, ọpọ awọn alufa ti wọn ko tẹriba fun ilana ijọ ni wọn sa kuro ninu ijọ wọn, ti ọpọlọpọ, ati alufa ati awọn eniyan san owo itanran, wọn lọ sinu ọgba ẹwọn, a jẹ wọn niya, a si pa awọn miran.

Iyapa ni o mu ki ijọ iṣaaju o wa iranlọwọ ijọba aye, eyi si pese ọna silẹ fun idagbasoke ijọ padi—ẹranko naa. Pọlu sọ wipe “Iyapa yoo wa, . . . a yoo si fi ọkunrin ẹṣẹ naa han.” 2 Tẹsalonika 2:3. Nitori naa iyipada ninu ijọ yoo pese ọna silẹ fun aworan ẹranko naa.

Bibeli kede wipe ki Oluwa o to wa, ifaṣẹyin ni ipo ẹsin yoo wa, eyi ti yoo dabi ti ọrundun akọkọ. “Ni igba ikẹyin akoko ewu yoo wa. Nitori ti awọn eniyan yoo jẹ olufẹ ara wọn, olojukokoro, afunnu, agberaga, asọrọ odi, aṣaigbọran si obi, alailọpe, alaimọ, alainifẹ, alailedarijini, abatẹnijẹ, alailekoraẹninijanu, onroro, alainifẹ ohun rere, onikupani, alagidi, ọlọkan giga, olufẹ faaji ju olufẹ Ọlọrun lọ; awọn ti wọn ni afarawe iwabiọlọrun, ṣugbọn ti wọn sẹ agbara rẹ.” 2 Timoti 3:1—5. “Ṣugbọn Ẹmi n tẹnumọ wipe, ni igba ikẹyin awọn miran yoo kuro ninu igbagbọ, wọn yoo si maa tẹle ẹmi ti n tanni jẹ ati ẹkọ awọn ẹmi eṣu.” 2 Timoti 4:1. Satani yoo ṣiṣẹ “pẹlu gbogbo agbara ati ami ati iṣẹ iyanu eke, pẹlu gbogbo itannije ninu aiṣododo.” Ati gbogbo awọn “ti ko gba ifẹ fun otitọ, ki a baa le gba wọn là” a yoo fi wọn silẹ lati gba “itanjẹ nla, ki wọn baa le gba èké gbọ.” 2 Tẹsalonika 2:9—11. Nigba ti a ba de ipo aiwabiọlọrun yii, abayọri kan naa ni yoo tẹle, gẹgẹ bii ti ọrundun akọkọ.

Iyatọ ti o wa ninu igbagbọ awọn ijọ Protestant ni awọn miran ro wipe o jẹ idi fun wọn lati gbagbọ wipe ko si ohun kan ti o le pa wọn pọ ṣọkan. Ṣugbọn fun ọpọ ọdun, ninu awọn ijọ Protestant, ifẹ ti o lagbara ti o si n dagba si ti wà ti o fẹ ibaṣepọ lori awọn ohun ikọni ti wọn jumọ gbagbọ papọ. Lati le ni ibaṣepọ yii, a ki yoo mẹnuba awọn koko ọrọ ti gbogbo wọn ko fẹnu ṣọkan le lori—bi o ti wu ki o ṣe pataki ninu Bibeli to.

Charles Beecher, ọ ninu iwaasu kan ni 1846 wipe iṣẹ iranṣẹ “awọn ijọ Protestant oniwaasu” ki i ṣe “wipe a da silẹ latari ibẹru eniyan nikan, ṣugbọn wọn n gbe, wọn n rin, wọn si n mí ninu ipo ti o kun fun iwa ibajẹ ti o si n mi si ẹran ara wọn nigba gbogbo lati pa otitọ lẹnu mọ, lati tẹ eekun wọn ba fun agbara ifaṣẹyin. Ṣe kii ṣe bi nnkan ti ri pẹlu Romu niyi? Ṣe kii ṣe wipe a n tun igbesi aye rẹ gbe bi? Ki ni a wa n wo niwaju wa? Ipade gbogboogbo miran! Apero agbaye! Ibaṣepọ awọn ijọ oniwaasu, ati ọrọ igbagbọ gbogboogbo!” Nigba ti a ba n ṣe eyi lati le ni ifọwọsowọpọ, wọn yoo fi ipa mu ni.

Nigba ti awọn ijọ ti wọn gbajugbaja ni United States ba wa ni iṣọkan lori awọn koko ẹkọ ti wọn fi ohùn ṣọkan le lori, wọn yoo mu ki ijọba ilu o mu ofin wọn ṣẹ lati mu agbekalẹ wọn duro, nigba naa ni Protestant Amẹrika yoo di aworan ijọ Romu, o daju wipe ifiyajẹ awọn ti ko ba tẹle wọn ni yoo tẹle.

Ẹranko naa ti o ni iwo meji “jẹ ki [paṣẹ ki] gbogbo eniyan, ati kekere ati nla, ọlọrọ ati talaka, ominira ati onde, gba ami kan ni ọwọ ọtun wọn, tabi niwaju ori wọn: ki ẹnikẹni ma baa le rà tabi tà, ayafi awọn ti wọn ba ni ami naa, tabi orukọ ẹranko naa, tabi iye orukọ rẹ.” Ifihan 13:16, 17. Ikilọ angẹli kẹta ni wipe: “Bi ẹnikẹni ba jọsin ẹranko naa ati aworan rẹ, ti o si gba ami rẹ siwaju ori rẹ, tabi si ọwọ

rẹ, oun naa ni yoo mu ninu ọti waini irunu Ọlọrun." "Ẹranko naa" ti a mẹnuba ninu iṣẹ iranṣẹ yii, ti ẹranko oniwomeji fi ipa muni jọsin rẹ, ni ẹranko akọkọ, tabi ẹranko ti o dabi amọtẹkun ti Ifihan 13—ijọ padi. "Aworan ẹranko naa" duro fun ijọ Protestant ti o ti fà sẹyin ti yoo fi ara han nigba ti ijọ Protestant ba wá iranlọwọ agbara ijọba lati mu ẹkọ rẹ ṣẹ. A koi tii sọ nipa "ami ẹranko naa."

Lẹyin ikilọ lati maṣe jọsin ẹranko naa ati aworan rẹ asọtẹlẹ sọ wipe: "Awọn wọnyi ni wọn pa ofin Ọlọrun mọ ati igbagbọ Jesu." Niwọn igba ti a ṣe afiwe awọn ti wọn pa ofin Ọlọrun mọ ni atako si awọn ti wọn jọsin ẹranko naa ati aworan rẹ ti wọn si gba ami rẹ, o nitumọ bi a ba sọ wipe pipa ofin Ọlọrun mọ ní ọna kan, ati riru ofin Ọlọrun ni ọna miran ni yoo jẹ iyatọ laarin awọn olujọsin Ọlọrun ati awọn olujọsin ẹranko naa.

Iwa ẹranko naa ti o ṣe pataki, ati nitori naa ti aworan rẹ ni titẹ ofin Ọlọrun loju. Danieli sọ nipa iwo kekere naa, ijọ padi wipe: "Yoo rò lati yi awọn akoko ati ofin pada." Danieli 7:25. Pọlu pe agbara kan naa ni "ẹni ẹṣẹ" ti yoo gbe ara rẹ ga ju Ọlọrun lọ. Asọtẹlẹ kan ran omiran lọwọ ni. Nipa yiyi ofin Ọlọrun pada nikan ni ijọ padi fi le gbe ara rẹ ga ju Ọlọrun lọ; ẹnikẹni ti o ba si mọọmọ pa ofin naa mọ gẹgẹ bi a ti ṣe yi pada yii yoo ma fi ọwọ ti o ga julọ fún agbara naa ti o yi pada. Iru igbọran yii si ofin ijọ padi yoo jẹ ami igbọran si popu dipo Ọlọrun.

Ijọ padi ti rò lati yi ofin Ọlọrun pada. Ofin keji ti ko faaye gba ijọsin ère ni a mu kuro ninu ofin ti a si yi ofin kẹrin pada ni ọna ti yoo gba fi aṣẹ fun pipa ọjọ kini mọ dipo ọjọ keje gẹgẹ bi ọjọ isinmi. Ṣugbọn awọn atẹle popu sọ wipe idi ti wọn fi yọ ofin keji silẹ ni wipe ko si idi fun, nitori pe o wa ninu ofin akọkọ, ati wipe wọn n funni ni ofin naa bi Ọlọrun ti ṣe fẹ ki o yeni ni. Eyi ko le jẹ iyipada ti woli naa sọtẹlẹ. A ṣe alaye iyipada ti a mọọmọ ṣe pẹlu igboya: "Yoo si rò lati yi awọn akoko ati ofin pada." Iyipada ninu ofin kẹrin ni o mu asọtẹlẹ yii ṣẹ pẹkipẹki. Nitori eyi nikan ni ijọ sọ wipe nipasẹ aṣẹ oun ni o fi ṣẹlẹ. Nibi aṣẹ ijọ paadi mọọmọ gbe ara rẹ ga ju Ọlọrun lọ.

Nigba ti a yoo da awọn olujọsin Ọlọrun mọ ni ọna pataki nipa bi wọn ti bọwọ fun ofin kẹrin,—nitori eyi ni ami agbara rẹ lati da ati ẹri fun ẹtọ Rẹ si ọwọ ati ijọsin eniyan,— a yoo da awọn olujọsin ẹranko naa mọ pẹlu akitiyan wọn lati bi ohun iranti Ẹlẹda wo lulẹ, lati le gbé aṣẹ Romu ga. Romu kọkọ ṣe ifọnnu rẹ nipa Sọnde ni igba ti o kọkọ lo agbara iṣelu, o lo o lati fi fi ipa muni lati pa ọjọ Sọnde mọ gẹgẹ bi "ọjọ Oluwa." Ṣugbọn Bibeli tọka si ọjọ keje ọsẹ, kii si i ṣe ọjọ kini gẹgẹ bi ọjọ Oluwa. Kristi sọ wipe: "Ọmọ eniyan pẹlu ni Oluwa ọjọ Isinmi." Ofin kẹrin sọ wipe: "Ọjọ keje ni ọjọ Isinmi Oluwa." Nipasẹ woli Aisaya, Oluwa pe e ni: "Ọjọ mimọ Mi." Maku 2:28; Aisaya 58:13.

Ọrọ ti a saba maa n sọ wipe Kristi ti yi ọjọ Isinmi pada ni ko le duro latari ọrọ ara Rẹ. Ninu iwaasu Rẹ lori oke, o sọ pe: “Maṣe ro wipe mo wa lati pa ofin ati awọn woli run: Emi ko wa lati parun, bikoṣe lati mu ṣe. Nitori lootọ ni mo wi fun yin, Titi ti ọrun ati aye yoo fi kọja lọ, kinkinni ninu ofin ki yoo kọja lọ laiṣẹ. Nitori naa ẹnikẹni ti o ba ru eyi ti o kere julọ ninu awọn ofin wọnyi, ti o si n kọni bẹẹ, oun ni a o pe ni kinkinni ni ijọba ọrun: ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba ṣe wọn, ti o si fi kọni, oun ni a o pe ni titobi ni ijọba Ọlọrun.” Matiu 5:17—19.

Awọn Protestant gba wipe Iwe Mimọ ko funni ni aṣẹ lati yi ọjọ isinmi pada. A sọ eyi kedere ninu atẹjade ti American Tract Society and the American Sunday School Union tẹ jade. Ọkan ninu awọn iṣẹ yii gba wipe “Majẹmu Tuntun dakẹ patapata nipa aṣẹ ti o han kedere nipa ọjọ isinmi [Sunday, ọjọ kini ọsẹ] tabi aṣẹ kan pato lati paamọ.

Omiran sọ wipe: “Titi di akoko iku Kristi, ko si iyipada kan ti a se lori ọjọ naa;” ati pe, “bi akọsilẹ ti fihan, wọn [awọn apostoli] ko . . . funni ni aṣẹ kan lati pa ọjọ keje tì, lati le pa ọjọ kini ọsẹ mọ.”

Awọn Roman Katoliki gba wipe ijọ wọn ni o ṣe ayipada ọjọ Isinmi, wọn si sọ wipe nipa pipa ọjọ Sọnde mọ, awọn Protestant n bọwọ fun agbara wọn. Ninu Catholic Catechism of Christian Religion, ni idahun si ibeere nipa ọjọ ti o yẹ ki a pa mọ ni igbọran si ofin kẹrin, a sọ gbolohun yii: “Ni akoko ofin atijọ, a ya Satide si mimọ; ṣugbọn ijọ ti o n gba ikọni Kristi, ti Ẹmi Ọlọrun si n dari fi ọjọ Sọnde rọpo Satide nitori naa bayii, a ko ya ọjọ keje si mimọ bikoṣe ọjọ kini. Nisinsinyii, Sọnde tumọ si, bayi, oun si ni ọjọ Oluwa.”

Gẹgẹ bi ami aṣẹ ijọ Katoliki, awọn onkọwe ijọ padi sọ wipe, “yiyi ọjọ Isinmi pada si Sọnde, eyi ti awọn Protestant fi ọwọ si; . . . nitori pe nipa pipa Sọnde mọ, wọn gba agbara ijọ lati paṣẹ ọjọ ayẹyẹ ati lati sọ wipe wọn wa labẹ ẹṣẹ.” Ki wa ni yiyi ọjọ Isinmi pada, bi ko ba n ṣe ami, tabi ohun idanimọ fun aṣẹ ijọ Romu—”ami ẹranko naa”?

Ijọ Romu koi tii ṣiwọ pipe ara rẹ ni ọga; nigba ti araye ati awọn ijọ Protestant ba gba ọjọ isinmi rẹ, ti wọn si kọ ọjọ Isinmi ti Bibeli silẹ, wọn fi ọwọ si ifọnu rẹ yii. Wọn le maa lo aṣẹ aṣa tabi awọn Baba ijọ ti wọn fi yi pada; ṣugbọn ni ṣiṣe eyi wọn n kọ ipilẹ ẹkọ gan an ti o pin wọn niya pẹlu Romu silẹ—wipe “Bibeli, ani Bibeli nikan ṣoṣo, ni ẹsin awọn Protestant.” Awọn atẹle popu ri wipe wọn n tan ara wọn jẹ, wọn mọọmọ n diju wọn si otitọ ti o wa ninu ọrọ naa. Bi a ba ti n fi oju rere wo awọn ẹgbẹ ti wọn n fẹ ki a pa ọjọ Sọnde mọ si, inu rẹ a dun, ọkan rẹ a balẹ wipe, laiṣe aniani, gbogbo ijọ Protestant yoo wa si abẹ asia Romu.

Awọn ara Romu sọ wipe “bi awọn Protestant ti n pa Sọnde mọ jẹ igbọran ti wọn n se laika ọrọ wọn si, si aṣẹ ijọ [Katoliki]. Fifi ipa muni lati pa ọjọ Sọnde mọ ti awọn Protestant ṣe jẹ fifi ipa muni ṣe ijọsin ijọ

padi—ẹranko naa. Awọn ti wọn ni oye aṣẹ ofin kẹrin ṣugbọn ti wọn yàn lati pa ọjọ isinmi eke mọ dipo ọjọ Isinmi tootọ n ṣe ijọsin agbara ti o pa a laṣẹ. Ṣugbọn nipa fifi ipa muni ṣe ojuṣe ẹsin nipasẹ agbara ijọba aye, awọn ijọ sọ ara wọn di aworan ẹranko naa; nitori naa fifi ipa muni pa ọjọ Sọnde mọ ní United States yoo jẹ fifi ipa muni jọsin ẹranko naa ati aworan rẹ.

Ṣugbọn awọn Kristẹni lati atẹyinwa pa ọjọ Sọnde mọ, wọn si ro wipe wọn n pa ọjọ Isinmi ti Bibeli mọ ni ṣiṣe eyi; ọpọlọpọ Kristẹni tootọ ṣi wà ninu gbogbo ijọ, laiyọ Roman Katoliki silẹ, ti wọn fi tọkantọkan gbagbọ wipe Sọnde ni ọjọ Isinmi ti Ọlọrun yan. Ọlọrun gba iṣotitọ erongba ati iduroṣinṣin wọn niwaju Rẹ. Ṣugbọn nigba ti a ba fi ofin muni pa ọjọ Sọnde mọ, ti araye si ti ni oye nipa ojuṣe ti ọjọ Isinmi tootọ, nigba naa, ẹnikẹni ti o ba ru ofin Ọlọrun, lati ṣe igbọran si ilana ti o wá lati ọdọ aṣẹ ti ko ju ti Romu lọ, yoo bọwọ fun aṣa popu ju ti Ọlọrun lọ. O n jọsin Romu ati agbara ti o n fi ipa muni ṣe igbọran si agbekalẹ Romu. O n jọsin ẹranko naa ati aworan rẹ. Nigba naa, bi awọn eniyan ti n kọ agbekalẹ ti Ọlọrun kede wipe o jẹ ami aṣẹ Rẹ silẹ, ti wọn si n bọwọ fun eyi ti Romu yan gẹgẹ bi ami agbara rẹ ọpọ, nipa eyi wọn a gba ami igbọran si Romu—"ami ẹranko naa." O ṣi di igba ti a ba gbe ọrọ naa ka iwaju awọn eniyan, ti o di dandan fun wọn lati yan laarin ofin Ọlọrun ati ofin eniyan, ki awọn ti wọn tẹsiwaju ninu aigbọran o to gba "ami ẹranko naa."

Ikilọ ti o banilẹru julọ ti a ṣe fun eniyan wà ninu iṣẹ iranṣẹ angẹli kẹta. Ẹṣẹ ti yoo fa ibinu Ọlọrun laini aanu nilati jẹ ẹṣẹ ti o lagbara. A ko fi awọn eniyan sinu okunkun nipa ọrọ pataki yii; a nilati ṣe ikilọ nipa ẹṣẹ yii fun araye ki idajọ Ọlọrun to bẹ wọn wo, ki gbogbo wọn le mọ idi ti a fi n jẹ wọn niya, ki wọn si ni anfani lati sá àsálà. Asọtẹlẹ sọ wipe angẹli akọkọ yoo ṣe ikede rẹ si "gbogbo orilẹ ede, ati ẹya ati ede ati eniyan." Ikilọ angẹli kẹta, eyi ti i ṣe ara iṣẹ iranṣẹ onipele mẹta naa yoo lọ kaakiri bẹẹ gẹgẹ. A ṣe afihan rẹ ninu asọtẹlẹ wipe angẹli ti o n fo ni agbede meji ọrun kede rẹ pẹlu ohùn ariwo; gbogbo aye ni yoo fiyesi.

Ninu koko ijakadi naa, gbogbo ẹlẹsin Kristẹni ni yoo pin si meji—awọn ti wọn n pa aṣẹ Ọlọrun mọ ati igbagbọ Jesu, ati awọn ti wọn n jọsin ẹranko naa ati aworan rẹ ti wọn si gba ami rẹ. Bi o tilẹ jẹ wipe ijọ ati ijọba yoo pa agbara wọn pọ lati fi ipa mu "gbogbo eniyan, ati kekere ati nla, ati ọlọrọ ati otoṣi, ati ominira ati onde" (Ifihan 13:16), lati gba "ami ẹranko naa," sibẹ awọn eniyan Ọlọrun ki yoo gba a. Woli ti Patmosi ri "awọn ti wọn ni iṣẹgun lori ẹranko naa, ati lori aworan rẹ, ati lori ami rẹ, ati lori iye oruko rẹ, wọn duro lori okun digi, pẹlu duru Ọlọrun" wọn si n kọ orin Mose ati ti Ọdọ Aguntan. Ifihan 15:2, 3.

26

Iṣẹ Atunṣe

Iṣẹ atunṣe ọjọ Isinmi ti a yoo ṣe ni ọjọ ikẹyin ni a sọ tẹlẹ ninu asọtẹlẹ Aisaya: “Bayii ni Oluwa wi, Ẹ pa idajọ mọ, ki ẹ si ṣe ododo: nitori ti igbala Mi sunmọ etile, ati lati fi ododo Mi han. Ibukun ni fun ẹni naa ti o ṣe eyi, ati ọmọ eniyan naa ti o ṣe e; ti o pa ọjọ Isinmi Mi mọ lati maṣe ba a jẹ, ti o si pa ọwọ rẹ mọ kuro ninu ṣiṣe ibi.” “Ọmọ ajeji ti o so ara rẹ po mọ Oluwa, lati sin In, ati lati fẹran orukọ Oluwa, lati jẹ iranṣẹ Rẹ, ẹnikẹni ti o ba yẹ ẹsẹ rẹ kuro ninu ọjọ Isinmi lati ba a jẹ, ti o si di majẹmu Mi mu; ani oun ni Emi yoo mu wa si oke mimọ Mi, Emi yoo si mu inu rẹ dun ninu ile adura Mi.” Aisaya 56:1, 2, 6, 7.

Awọn ọrọ wọnyi ni i ṣe pẹlu akoko Kristẹni gẹgẹ bi o ti fi ara han: “Oluwa Ọlọrun Ẹni ti o ṣa atanu Israeli jọ wi pe, Emi yoo ṣa awọn miran jọ sọdọ rẹ, pẹlu awọn ti a ti ṣa jọ sọdọ rẹ.” Ẹsẹ 8. Nibi ni a ti ṣe asọtẹlẹ kiko awọn keferi wọle nipasẹ iyinrere. A si ṣe ibukun sori awọn ti yoo bọwọ fun ọjọ Isinmi nigba naa. Ni bayii ojuṣe ofin kẹrin gun lọ kọja agbelebu, ajinde, igoke re ọrun Kristi, titi fi di akoko ti awọn iranṣẹ Rẹ yoo waasu iṣẹ iranṣẹ iroyin ayọ si gbogbo orilẹ ede.

Oluwa pa woli kan naa laṣẹ wipe: “Di ẹri naa, fi edidi di ofin naa laarin awọn ọmọlẹyin Mi.” Aisaya 8:16. A ri edidi ofin Ọlọrun ninu ofin kẹrin. Eyi nikan ni aarin awọn mẹwa, ni o sọ orukọ ati àpèlé Afunnilofin. O pe E ni Ẹlẹda ọrun ati aye nipa eyi o fihan wipe O ni ẹtọ si ijọsin ju ohunkohun lọ. Laisi ilana yii, ko si ohunkohun ninu Ofin Mẹwa lati ṣe afihan aṣe ẹni ti o funni ni ofin. Nigba ti agbara ijọ padi yi ọjọ Isinmi pada, a mu edidi kuro lara ofin. A pe awọn ọmọlẹyin Jesu lati da pada nipa gbigbe ọjọ Isinmi ti ofin kẹrin ga si ipo ti o tọ si gẹgẹ bi ohun iranti Ẹlẹda ati ami aṣẹ Rẹ.

“Si ofin ati si ẹri.” Nigba ti awọn ikọni ati ironu ti wọn tako ara wọn wọpọ, ofin Ọlọrun jẹ odiwọn ti ko baku eyi ti a nilati fi dan gbogbo ero, ikọni ati ironu wo. Woli naa sọ pe: “Bi wọn ko ba sọrọ gẹgẹ bi ọrọ yii, nitori pe ko si imọlẹ ninu wọn ni.” Ẹsẹ 20.

Lẹẹkan si a paṣẹ: “Kigbe kikan, maṣe da sí, gbe ohun rẹ soke bii kakaki, ki o si fi irekọja awọn eniyan Mi han wọn, ati ile Jakobu ẹṣẹ wọn.” Ki i ṣe aye buburu yii, bikoṣe awọn ti Ọlọrun pe ni “eniyan Mi” ni a nilati bawi fun irekọja wọn. O tẹsiwaju: “Sibẹ wọn n wa ni ojoojumọ, wọn si n fẹ lati mọ ọna Mi gẹgẹ bi orilẹ ede ti n ṣe ododo, ti ko kọ agbekalẹ Ọlọrun wọn silẹ.” Aisaya 58:1, 2. Nibi ni a ti ṣe alaye ẹgbẹ kan ti wọn ro wipe wọn jẹ olododo ti o si dabi ẹnipe wọn ni ifẹ nla si iṣẹ Ọlọrun, ṣugbọn ibawi lile ti o lẹru Ẹni ti n yẹ ọkan wo fihan wipe wọn n tẹ ilana mimọ loju.

Bayii woli naa tọka si ilana ti wọn kọ silẹ: “Ẹyin yoo gbe ipilẹ ọjọ pipẹ ro; a yoo si pe yin ni olutun ibi èya kọ, olumupada ọna nì lati maa gbe inu rẹ. Bi iwọ ba yi ẹṣẹ rẹ pada kuro ninu ọjọ Isinmi lati ṣe afẹ rẹ ni ọjọ mimọ Mi; ti o si pe ọjọ Isinmi Mi ni adun, ọjọ mimọ Oluwa, ọlọwọ; ti iwọ si bọwọ fun, ti o ko rin ni ọna ara rẹ, tabi wa afẹ rẹ tabi sọ ọrọ ara rẹ: nigba naa ni iwọ yoo ni inu didun ninu Oluwa.” Ẹsẹ 12—14. Asọtẹlẹ yii ni itumọ ni akoko wa yii pẹlu. A da alafo sinu ofin Ọlọrun nigba ti agbara Romu yi ọjọ Isinmi pada. Ṣugbọn akoko ti to lati tun agbekalẹ mimọ naa ṣe. A nilati tun alafo naa kọ ki a si gbe ipilẹ ọlọjọ pipẹ naa ro.

Ẹlẹda yaa si mimọ pẹlu isinmi ati ibukun, Adamu pa ọjọ Isinmi mọ nigba ti o wa ni ailẹṣẹ ni Edẹni mimọ; o pa a mọ nigba ti o ronupiwada lẹyin ti o ṣubu, nigba ti a le kuro ninu ile alayọ rẹ. Gbogbo awọn baba nla ni wọn pa a mọ, lati ori Abeli titi de ori Noah olododo, de ori Abrahamu, titi de Jakọbu. Nigba ti awọn ti a yan wa ninu igbekun ni Ijibiti, ọpọlọpọ wọn, laarin ẹsin ibọrisa ti o gbilẹ kan, padanu imọ wọn nipa ofin Ọlọrun; ṣugbọn nigba ti Oluwa gba Israeli silẹ, O kede ofin Rẹ si awujọ wọn ni ọna ti o banilẹru, ki wọn le mọ ifẹ Rẹ, ati ki wọn le bẹru Rẹ, ki wọn si ṣe igbọran si titi lae.

Lati ọjọ naa lọ titi di akoko yii imọ ofin Ọlọrun ti wa ninu aye, ti a si ti n pa ọjọ Isinmi ofin kẹrin mọ. Bi o tilẹ jẹ wipe “ẹni ẹṣẹ” ṣe aṣeyọri ninu titẹ ọjọ mimọ Ọlọrun labẹ ẹṣẹ rẹ, sibẹ ani ni akoko ijẹgaba rẹ, awọn olootọ wa ninu ibi kọlọfin wọn ti wọn ti n bọwọ fun. Lati akoko Atunṣe, awọn kan wà lati iran de iran ti wọn n pa a mọ. A n jẹri latigbadegba nipa iwalaaye titi lae ofin Ọlọrun ati ojuṣe mimọ ti ọjọ Isinmi ti ìgbà ti a dá aye, bi o tilẹ jẹ wipe eyi saba maa n waye laarin ẹgan ati inunibini.

Awọn otitọ wọnyi, ti a gbekalẹ ninu Ifihan 14 ni asopọ pẹlu “iyinrere ainipẹkun” yoo ya ijọ Kristi sọtọ ni akoko ifarahan Rẹ. Nitori

latari ikede iṣẹ iranṣẹ onipelemẹta naa a kede wipe: “Iwọnyi ni awọn ti wọn pa ofin Ọlọrun ati igbagbọ Jesu mọ.” Iṣẹ iranṣẹ yii ni eyi ti o kẹyin ti a o funni ki Oluwa o to wa. Lọgan lẹyin ti a ṣe ikede rẹ, woli naa ri Ọmọ eniyan, ti O n bọwa ninu ogo lati wa kore aye.

Awọn ti wọn gba imọlẹ nipa ibi mimọ ati iwatiti lae ofin Ọlọrun kun fun ayọ ati iyanu bi wọn ti ri ẹwa ati irẹpọ agbekalẹ otitọ ti o ṣi si iye wọn. Wọn fẹ ki imọlẹ ti o ṣe iyebiye si wọn o tan si gbogbo Kristẹni, wọn si gbagbọ wipe tayọtayọ ni wọn a fi gba a. Ṣugbọn ọpọlọpọ ti wọn pe ara wọn ni atẹle Kristi ko ni gba otitọ ti yoo mu wọn wa ni iṣọta pẹlu aye. Igbọran si ofin kẹrin nilo irubọ ti ọpọlọpọ ko le ṣe.

Bi a ti n ṣe alaye ojuṣe ti ọjọ isinmi, ọpọlọpọ ni wọn ronu ni ọna ti aye. Wọn sọ pe: “A ti n pa ọjọ Sọnde mọ lati ẹyin wa, awọn baba wa pa a mọ, ọpọlọpọ awọn eniyan rere ti wọn jẹ ọlufọkansin ni wọn ku pẹlu ayọ nigba ti wọn n pa a mọ. Ti wọn ba tọna, awa naa tọna pẹlu. Pipa ọjọ Isinmi tuntun yii mọ yoo mu ki ọpọlọpọ wa ni airẹpọ pẹlu aye, a ki yoo si ni ipa lori wọn. Ki ni ẹgbẹ kekere ti n pa ọjọ keje mọ ni ireti lati ṣe laarin ọgọọrọ ninu aye ti wọn n pa ọjọ Sọnde mọ?” Pẹlu iru iṣọwọsọrọ bayi ni awọn Ju fi gbiyanju lati da ara wọn lare nigba ti wọn kọ Kristi silẹ. Ọlọrun gba awọn baba wọn pẹlu ọrẹ ẹbọ wọn, ki lo wa di awọn ọmọ lọwọ lati ri igbala nipa titẹle ilana kan naa? Bẹẹ gẹgẹ ni akoko Luther awọn atẹle popu ronu wipe awọn Kristẹni tootọ ku ninu igbagbọ Katoliki, nitori naa ẹsin naa tó fun igbala. Iru iṣọwọronu yii yoo ṣe idena gbogbo idagbasoke igbagbọ ẹsin ati iṣesi.

Ọpọ sọ wipe pipa ọjọ Sọnde mọ jẹ ikọni ti a fi idi rẹ mulẹ ati iṣesi ti ijọ ti tan kalẹ fun ọpọlọpọ ọdun. Ni atako si iṣọwọronu yii, a ri wipe ọjọ Isinmi pẹlu iṣọwọpaamọ jẹ eyi ti o pẹ ti o si tan kalẹ, o pẹ ani bi aye ti pẹ funra rẹ, o si ni ifọwọsi awọn angẹli ati ti Ọlọrun. Nigba ti a ṣe ipilẹ aye, nigba ti awọn irawọ owurọ jumọ kọrin papọ, ti gbogbo awọn ọmọ Ọlọrun kigbe fun ayọ, nigba naa ni a ṣe ipilẹ ọjọ Isinmi. Jobu 38:6, 7; Jẹnẹsisi 2:1—3. Agbekalẹ yii nilo ibọwọfun wa; ki i ṣe aṣẹ eniyan ni o gbe kalẹ, ko si sinmi lori ikọni eniyan. Arugbo Ọjọ ni o fi idi rẹ lelẹ, ọrọ ayeraye Rẹ ni o si pa a laṣẹ.

Bi a ti n pe akiyesi awọn eniyan si koko ọrọ atunṣe nipa ọjọ isinmi, awọn alufa ti wọn gbajugbaja yi ọrọ Ọlọrun pada, wọn ṣe itumọ eri rẹ ni ọna ti o mu ki ẹni ti o ba fẹ mọ si dakẹ. Awọn ti wọn ko wa inu Iwe Mimọ funra wọn fara mọ lati gba idahun ti o wa ni ibamu pẹlu ifẹ ọkan wọn. Nipa ariyanjiyan, ọgbọn ẹwẹ, aṣa awọn Baba, ati aṣẹ ijọ, ọpọlọpọ gbiyanju lati bi otitọ ṣubu. Awọn ti wọn n kede rẹ ṣi yi si Bibeli lati fi idi ẹsẹ ofin kẹrin mulẹ. Awọn onirẹlẹ eniyan, ti wọn kun fun ọrọ otitọ nikan, duro lati kọju ija si atako awọn ọmọwe, wọn si n ri pẹlu iyalẹnu ati ibinu wipe ète wọn ko ni agbara lati tako ironu ti

o ja geere awọn ti wọn kun fun Iwe Mimọ dipo ọgbọn arekereke ti o wa ni ile ẹkọ.

Nitori ti wọn ko ni ẹri Bibeli ni ọdọ wọn, ọpọlọpọ laikaarẹ n sọ wipe—wọn ti gbagbe bi wọn ti lo iru ọrọ kan naa lati tako Kristi ati awọn apostoli Rẹ: “Kilode ti awọn eniyan nla wa ko fi ni oye nipa ọjọ Isinmi yii? Ṣugbọn awọn perete ni wọn gba a gbọ bii ti yin. Ẹ kole tọna nigba ti gbogbo awọn ọmọwe aye a wa ṣina.”

Eniyan ko nilo ju ki o sọ nipa awọn ikọni Iwe Mimọ ati itan iṣesi Oluwa pẹlu awọn eniyan Rẹ latẹyinwa lati le tako iṣọwọsọrọ yii. Ọlọrun n ṣiṣẹ nipasẹ awọn ti wọn tẹti si ti wọn si n ṣe ohun ti O wi, awọn ti o jẹ wipe, bi o ba nilo bẹẹ, wọn a sọ otitọ ti ko dun mọni leti, awọn ti wọn ko bẹru lati bá ẹṣẹ ti o gbilẹ wi. Idi ti ki I fi saba maa n yan awọn ọmọwe ati awọn ti wọn ni ipo giga lati jẹ aṣaaju ninu ẹgbẹ alatunṣe ni wipe wọn gbẹkẹle ohun ti wọn gbagbọ, ninu ero wọn ati ilana wọn nipa Ọlọrun, wọn ko si ri wipe wọn nilo ẹkọ lati ọdọ Ọlọrun. Awọn ti wọn ni ibaṣepọ timọtimọ pẹlu Orisun ọgbọn nikan ni wọn le ni oye tabi ṣe alaye Iwe Mimọ. Awọn ti wọn ni ẹkọ kekere ni ile iwe ni a saba maa n pe lati ṣe ikede otitọ, ki i ṣe nitori pe wọn ko mọwe, ṣugbọn nitori pe wọn ko ri ara wọn bi ẹni ti o to tan, ti Ọlọrun ko le kọ. Wọn kẹkọ ninu ile ẹkọ Kristi, irẹlẹ ati igbọran wọn si sọ wọn di nla. Ni fifun wọn ni imọ otitọ Rẹ, Ọlọrun bọwọ fun wọn ni ọna ti o jẹ wipe ọwọ aye ati titobi eniyan jẹ asan ni afiwe.

Ọpọlọpọ awọn Onireti kọ otitọ nipa ibi mimọ ati ofin Ọlọrun silẹ, ọpọlọpọ si kọ igbagbọ wọn ninu ẹgbẹ ipadabọ silẹ, wọn gba ero ti kò peye tó, ti wọn tako ara wọn nipa iṣẹ naa. Awọn miran bọ sinu aṣiṣe lati maa da akoko fun wiwa Kristi. Imọlẹ ti o wa n tan bayii lori koko ọrọ ibi mimọ i ba fihan wọn wipe ko si akoko isọtẹlẹ ti o lọ de akoko ipadabọ lẹẹkeji mọ; wipe a ko sọ asọtẹlẹ nipa akoko gan an ti wiwa yii yoo jẹ. Ṣugbọn ni yiyi kuro ninu imọlẹ, wọn tẹsiwaju lati da akoko fun Oluwa lati wá, bẹẹ si ni wọn n ri ijakulẹ.

Nigba ti awọn ijọ Tẹsalonika gba ero ti ko tọ nipa wiwa Kristi, apostoli Pọlu gba wọn niyanju lati fi ọrọ Ọlọrun dan ireti ati afojusun wọn wo daradara. O sọ fun wọn awọn asọtẹlẹ ti wọn ṣe afihan awọn iṣẹlẹ ti yoo ṣẹlẹ ki Kristi o to wa, o si fihan wipe wọn ko ni idi lati reti Rẹ ni akoko wọn. “Ẹ maṣe jẹ ki ẹnikẹni o tan yin jẹ ni ọnakọna.” (2 Tẹsalonika 2:3), ni ọrọ ikilọ rẹ. Bi wọn ba wa ni ireti ti Iwe Mimọ ko fi ọwọ si, wọn a ṣe ohun ti ko tọna; ijakulẹ a mu ki awọn alaigbagbọ o kẹgan wọn, wọn a si wa ninu ewu ati fi ara silẹ fun ijakulẹ, wọn a wa ninu idanwo lati ṣe iyemeji nipa awọn otitọ ti wọn ṣe pataki fun igbala wọn. Iyanju apostoli naa si awọn ara Tẹsalonika ní ẹkọ nla fun awọn ti wọn wa laaye ni akoko ikẹyin. Ọpọ awọn Onireti ni wọn ro

wipe ayafi bi wọn ba gbe igbagbọ wọn le akoko kan pato fun wiwa Oluwa, wọn ko ni ni itara to bẹẹni wọn ko ni mura ninu iṣẹ imurasilẹ. Ṣugbọn bi ireti wọn ti n ru soke, ti o si n pade ijakulẹ, igbagbọ wọn a mi debi pe ko ni ṣe e ṣe fun wọn mọ lati gba awọn otitọ nla ti isọtẹlẹ.

Ọlọrun ni o ṣe eto iwaasu nipa akoko kan pato fun idajọ ni igba iwaasu iṣẹ iranṣẹ akoko. Iṣiro akoko isọtẹlẹ eyi ti iṣẹ iranṣẹ naa duro le lori, ti o fi si opin 2300 ọjọ ni akoko ikore 1844, duro ni aiyẹ. Akitiyan latigbadegba lati ri ọjọ tuntun fun ibẹrẹ ati opin akoko isọtẹlẹ ati iṣọwọronu ti ko peye ti wọn nilo lati fi idi awọn ọrọ wọnyi mulẹ yi ọkan ọpọlọpọ kuro ninu otitọ akoko yii, bẹẹ ni o tun ko ẹgan ba gbogbo akitiyan lati ṣe alaye awọn asọtẹlẹ. Bi wọn ba ṣe n da akoko fun ipadabọ lẹẹkeji to, ati bi a ba ṣe fi kọni to, bẹẹ ni o ṣe tẹ erongba Satani lọrun to. Nigba ti akoko naa kọja, o ru ẹsin ati ẹgan awọn ti n kede rẹ soke, bayi ni o ṣe ko ẹgan ba ẹgbẹ ipadabọ nla ti 1843 ati 1844. Awọn ti wọn tẹsiwaju ninu aṣiṣe yii yoo mu ọjọ ti o lọ jinna réré gẹgẹ bi akoko wiwa Kristi. Bayii ni wọn a ṣe ni ifọkanbalẹ ninu igbẹkẹle asan wọn, ọpọlọpọ ni yoo si wa ninu itanjẹ titi ti a fi pẹ ju.

Itan Israeli atijọ jẹ apejuwe ti o yanilẹnu fun iriri ẹgbẹ Onireti. Ọlọrun dari awọn eniyan Rẹ ninu ẹgbẹ Onireti, ani bi O ti dari awọn ọmọ Israeli lati Ijibiti wa. Ninu ijakulẹ nla a dan igbagbọ wọn wo bi a ti dan awọn Heberu wo ni okun pupa. Bi o ba ṣe wipe wọn gbẹkẹle ọwọ ti o ti n dari wọn ninu iriri wọn latẹyinwa ni, wọn i ba ri igbala Ọlọrun. Bi o ba ṣe wipe gbogbo awọn ti wọn ṣiṣẹ pẹlu iṣọkan ninu iṣẹ 1844 ni wọn gba iṣẹ iranṣẹ angẹli kẹta, ti wọn si waasu rẹ ninu agbara Ẹmi Mimọ ni, Oluwa i ba ṣe iyanu pẹlu akitiyan wọn. Igbi imọlẹ i ba tan si ori aye. Ni ọdun diẹ sẹyin, a ba ti ṣe ikilọ fun awọn olugbe aye, iṣẹ aṣekagba i ba ti pari, Kristi i ba si ti wa fun irapada awọn eniyan Rẹ.

Ki i ṣe ifẹ Ọlọrun ni ki Israeli o rin ninu aginju fun ogoji ọdun; O nifẹ lati dari wọn taara lọ si ilẹ Kenaani ki O si fi ẹṣẹ wọn mulẹ nibẹ gẹgẹ bi eniyan mimọ, alayọ. Ṣugbọn "wọn ko le wọ ibẹ nitori aigbagbọ." Heberu 3:19. Nitori ipẹyinda ati ifasẹyin wọn, wọn ṣegbe ninu aṣalẹ, a si gbe awọn miran dide lati wọ ilẹ ileri. Ni ọna kan naa, ki i ṣe ifẹ Ọlọrun ki wiwa Kristi o pẹ bayii, ki awọn eniyan Rẹ o ṣi wa ninu aye ẹṣẹ ati ibanujẹ fun ọdun pipẹ. Ṣugbọn aigbagbọ ni o pin wọn niya kuro ni ọdọ Ọlọrun. Bi wọn ti kọ lati ṣe iṣẹ ti O fun wọn, a gbe awọn miran dide lati kede iṣẹ iranṣẹ naa. Ninu aanu si araye, Jesu fa wiwa Rẹ sẹyin, ki ẹlẹṣẹ le ni anfani lati gbọ ikilọ naa ki wọn si ri aabo ninu Rẹ ki a to tu ibinu Ọlọrun sita.

Bayi gẹgẹ bi o ti wa ni iṣaaju iwaasu otitọ ti yoo ba ẹṣẹ ati aṣiṣe wi yoo ru atako soke. "Gbogbo ẹni ti n wuwa ibi korira imọlẹ, bẹẹ ni ki

yoo wa si imọlẹ ki a ma baa ba iṣẹ rẹ wi." Johanu 3:20. Bi awọn eniyan ti ri wipe wọn ko le gbe ara wọn lẹyin pẹlu Iwe Mimọ, ọpọlọpọ pinu lati maṣe naani ewu ti o wa nibẹ, pẹlu ẹmi arankan, wọn ṣe atako iwa ati erongba awọn ti wọn duro lati gbeja otitọ, ti awọn eniyan ko fẹran. Ohun kan naa ni o n ṣẹlẹ ni gbogbo igba. A sọ wipe Elija ni ẹni ti n yọ Israeli lẹnu, Jeremaya jẹ ọdalẹ, Pọlu jẹ ẹni ti n ba tẹmpili jẹ. Lati ọjọ naa lọ titi di oni, a si maa n pe awọn ti wọn ba maa ṣe igbọran si otitọ ni ọlọtẹ, ẹlẹkọ eke, ati oluyapa. Ọpọlọpọ ti aigbagbọ wọn pọ to bẹẹ gẹẹ ti wọn ko ni igbagbọ ninu ọrọ isọtẹlẹ ti o daniloju, yoo gba laiṣe aiwadi ẹsunkẹsun ti a ba fi kan awọn ti yoo ba ẹṣẹ ti gbogbo eniyan fẹran wi. Iru ẹmi yii yoo tubọ maa pọ si. Bibeli si sọ ọ ni gbangba wipe akoko n sunmọ etile ti ofin ilu yoo tako ofin Ọlọrun gidigidi debi wipe ẹnikẹni ti yoo ba ṣe igbọran si gbogbo ofin Ọlọrun yoo ni igboya lati gba ẹgan ati itiju bi aṣebi.

Pẹlu eleyi, kini ojuṣe ojiṣẹ otitọ? Ṣe ki o sọ wipe a ko gbọdọ waasu otitọ ni, nigba ti o jẹ wipe ko le ṣe ju lati mu ki awọn eniyan o yago fun tabi ki wọn ṣe atako rẹ lọ? Rara; ko ni idi kankan lati maṣe waasu ẹri ọrọ Ọlọrun nitori ti o fa atako ju bi awọn Alatunṣe iṣaaju ti ni lọ. A ṣe akọsilẹ ijẹwọ igbagbọ tí awọn eniyan mimọ ati ajẹriku ṣe fun anfani awọn iran ti n bọ lẹyin. Awọn apẹẹrẹ ti wọn duro titi lae, fun iwa mimọ ati iduro ṣinṣin wa lati fun awọn ti a pe bayi lati duro gẹgẹ bi ajẹri fun Ọlọrun ni igboya. Wọn gba oore ọfẹ ati otitọ, ki i ṣe fun ara wọn nikan, ṣugbọn nipasẹ wọn, ki imọ Ọlọrun le tan ka ilẹ aye. Njẹ Ọlọrun fun awọn iransẹ Rẹ ni imọlẹ ni akoko yii bi? Nitori naa ki wọn jẹ ki o tan sinu aye.

Ni igba atijọ Oluwa sọ fun ẹnikan ti o sọrọ ni orukọ Rẹ wipe: "Ile Israeli ki yoo tẹti si ọ; nitori ti wọn ki yoo gbọ Mi." Sibẹ, O sọ pe: "Iwọ yoo sọ ọrọ Mi fun wọn, boya wọn yoo gbọ, tabi boya wọn ki yoo gbọ." Isikiẹli 3:7; 2:7. A pa aṣẹ yii fun awọn iransẹ Ọlọrun ni akoko yii pe: "Gbe ohùn soke bi kakaki, ki o si fi irekọja awọn eniyan Mi han wọn, ati ẹṣẹ ile Israeli."

Ni bi anfani rẹ ba ti pọ to, gbogbo eniyan ti wọn gba imọlẹ otitọ ni wọn ni ojuṣe ọlọwọ ati ẹlẹru kan naa bii ti woli Israeli ẹni ti ọrọ Ọlọrun wa ba nì wipe: "Ọmọ eniyan, Mo ti yan ọ ni alore si ile Israeli; nitori naa iwọ yoo gbọ ọrọ ni ẹnu Mi, iwọ yoo si kì wọn nilọ fun Mi. Nigba ti mo ba sọ fun ẹlẹṣẹ, Iwọ ẹlẹṣẹ, kiku ni iwọ yoo ku; bi iwọ ko ba sọrọ lati ki ẹlẹṣẹ naa nilọ kuro ni ọna rẹ, ẹlẹṣẹ naa yoo ku ninu ẹṣẹ rẹ; ṣugbọn ẹjẹ rẹ ni Emi yoo beere ni ọwọ rẹ. Ṣugbọn bi iwọ ba ki ẹlẹṣẹ naa nilọ lati yipada kuro ninu ọna rẹ, bi ko ba yipada kuro ninu ọna rẹ, yoo ku ninu ẹṣẹ rẹ, ṣugbọn iwọ ti gba ọkan rẹ là." Isikiẹli 33:7—9.

Idiwọ nla ti o ba gbigba ati wiwaasu otitọ ni wipe o n mu inira ati ẹgan wa. Eyi nikan ni atako si otitọ ti awọn ti n waasu rẹ koi tii le dahun. Ṣugbọn eleyi ko le di atẹle Kristi tootọ lọwọ. Awọn wọnyi ko ni duro titi ti gbogbo eniyan a fi gba otitọ. Nigba ti wọn mọ ojuṣe wọn, wọn mọọmọ gba agbelebu, pẹlu Pọlu apostoli wọn ri "inira kekere wa, ti o wa fun igba diẹ ṣiṣẹ ogo ti o tayọ jọjọ, ti o si wuwo fun wa," pẹlu ẹni ogbó ni, "wọn ri ẹgan Kristi gẹgẹ bi ọrọ ti o pọ ju iṣura Ijibiti lọ." 2 Kọrintin 4:17; Heberu 11:26.

Iru iṣẹ ti o ba wu ki wọn maa ṣe, awọn olujọsin aye ninu ọkan wọn nikan ni wọn maa n wuwa nitori ayika dipo nitori ohun ti wọn gbagbọ ninu ọrọ ẹsin. A yan lati ṣe ohun ti o tọ nitori ti o tọ, a yoo si fi atubọtan rẹ lé Ọlọrun lọwọ. Aye ri gbogbo iṣẹ atunṣe ti wọn n ṣe ninu rẹ nitori awọn ti wọn wuwa nitori igbagbọ ọkan wọn, ti wọn nigbagbọ ti wọn tun nigboya. Iṣẹ atunṣe fun akoko yii yoo tẹsiwaju nipasẹ iru awọn eniyan wọnyi.

Bayii ni Oluwa wi: "Ẹ gbọ temi ẹyin ti o mọ ododo, ẹyin eniyan ti o ni ofin Mi ninu ọkan yin; ẹ maṣe bẹru ẹgan eniyan, ki ẹ ma si ṣe foya ẹgan. Nitori kokoro yoo jẹ wọn bi ẹwu, ìdin yoo si jẹ wọn bi owu: ṣugbọn ododo Mi yoo wa titi lae, ati igbala Mi lati iran de iran." Aisaya 5:7, 8.

27

Isọji Ti Ode Oni

Ni ibikibi ti a ba ti fi otitọ waasu ọrọ Ọlọrun, o maa n ni abajade ti yoo jẹri si wipe ọdọ Ọlọrun ni o ti wa. Ẹmi Ọlọrun maa n tẹle iṣẹ iranṣẹ awọn iranṣẹ Rẹ, ọrọ naa si maa n ni agbara. Awọn ẹlẹṣẹ a ri ti ẹri ọkan wọn taji. “Imọlẹ ti o n tan si gbogbo eniyan ti o wa ninu aye” tan si ibi kọlọfin ọkan wọn, awọn ohun ikọkọ ti okunkun si farahan. Wọn ni idalẹbi ti o jinlẹ ninu ọkan ati iye wọn. Wọn ni idalẹbi ẹṣẹ ati ododo ati ti idajọ ti n bọ. Wọn ni oye ododo Jehofa, ẹru si ba wọn lati fi ara han niwaju Oluyẹ-ọkan-wo ninu ẹbi ati aimọ wọn. Ninu irora ọkan wọn, wọn kigbe sita: “Tani yoo gba mi lọwọ ara iku yii?” Bi agbelebu Kalfari, pẹlu ẹbọ ayeraye rẹ fun ẹṣẹ eniyan ti farahan, wọn ri wipe ko si ohunkohun ayafi oore ọfẹ Kristi nikan ni o le ṣe etutu fun irekọja wọn; eyi nikan ni o le ba eniyan laja pẹlu Ọlọrun. Pẹlu igbagbọ ati irẹlẹ, wọn tẹwọgba Ọdọ Aguntan Ọlọrun, ti O ko ẹṣẹ araye lọ. Nipasẹ ẹjẹ Jesu wọn ni “imukuro awọn ẹṣẹ ti wọn ti koja.”

Awọn ọkan wọnyi so eso ti o wa ni ibamu pẹlu ironupiwada. Wọn gbagbọ, a ṣe itẹbọmi fun wọn, wọn si dide lati rin ninu igbe aye ọtun—ẹda tuntun ninu Kristi Jesu, ki i ṣe lati rin gẹgẹ bi ifẹkufẹ ara ti atẹyinwa, ṣugbọn nipa igbagbọ Ọmọ Ọlọrun lati tẹle igbesẹ Rẹ, lati fi iwa Rẹ han ati lati sọ ara wọn di mimọ gẹgẹ bi O ti jẹ mimọ. Wọn wa fẹran awọn ohun ti wọn korira tẹlẹ, wọn si korira awọn ohun ti wọn fẹran nigbakan ri. Agberaga ati afunnu di onirẹlẹ ati ọlọkan tutu. Olufẹ asan ati ẹni ti o jọ ara re loju di ẹni ti n ronu ati oniwapẹlẹ. Alaimọ di ẹni ti n bọwọ fun nnkan. Ọmuti di ẹni ti ara rẹ balẹ, onifẹkufẹ di ẹni mimọ. Wọn gbe iṣeraeniloṣọ asan aye tì si ẹgbẹ kan. Awọn Kristẹni ko wa “ọṣọ ode ti irun didi, ati ti wiwọ wura tabi

wiwọ aṣọ; . . . ṣugbọn ọkunrin ti o pamọ ni ọkan, eyi ti ko le dibajẹ, ani ohun ọṣọ ti ẹmi idakẹjẹ ati irẹlẹ ti o ṣeyebiye niwaju Ọlọrun.” 2 Peteru 3:3, 4.

Isọji mu iyè-ọkàn ti n wo finifini ati irẹlẹ wa. Wọn n ṣe ipẹ atọkanwa ti o lọwọ fun ẹlẹṣẹ, nipa kikede aanu fun ẹni ti Kristi fi ẹjẹ Rẹ ra. Awọn ọkunrin ati obinrin gbadura, wọn ba Ọlọrun jijakadi fun igbala ọkan. A n ri eso iru isọji yii ninu ọkan ti wọn ko sa fun iṣẹra-ẹni ati ifiara-ẹni-rubọ, ṣugbọn ti inu wọn dun wipe a ka wọn yẹ lati le jiya ẹgan ati idanwo nitori Kristi. Awọn eniyan ri iyipada ninu igbesi aye awọn ti wọn n pe orukọ Jesu. Awujọ ri ibukun nitori iṣesi wọn. Wọn n kojọ pọ pẹlu Kristi, wọn n gbin si ti Ẹmi lati le kore iye ainipẹkun.

A le sọ nipa wọn wipe: “Ẹyin banujẹ si ironupiwada.” “Nitori ibanujẹ ti iwabiọlọrun n ṣiṣẹ ironupwiada si igbala ti a ki yoo kabamọ rẹ: ṣugbọn ibanujẹ ti aye n ṣiṣẹ iku. Kiyesi ohun kan yii, wipe ẹyin banujẹ ni ọna ti Ọlọrun, iru iṣọra wo ni o mu wa ninu yin, bẹẹ ni, iru ibinu wo, bẹẹ ni, iru ibẹru wo, bẹẹ ni, iru igbonara wo, bẹẹ ni, iru itara wo, bẹẹ ni, iru igbẹsan wo! Ninu ohun gbogbo ẹ fi han wipe ẹ mọ ninu ọrọ naa.” 2 Kọrintin 7:9—11.

Eyi jẹ abayọri iṣẹ Ẹmi Ọlọrun. Ko si ẹri fun ironupiwada tootọ ayafi ti o ba ṣe iṣẹ atunṣe. Bi o ba da ẹjẹ pada, bi o ba da ohun gbogbo ti o ba jí pada, bi o ba jẹwọ ẹṣẹ rẹ, ti o fẹran Ọlọrun ati eniyan ẹlẹgbẹ rẹ, o nilati da ẹlẹṣẹ loju wipe yoo ni alaafia pẹlu Ọlọrun. Iru awọn ohun ti wọn maa n tẹle akoko isọji ẹsin ni aye atijọ ni eyi. Bi a ba ti ibi eso wọn wo o, o fihan wipe wọn jẹ alabukunfun Ọlọrun ninu igbala eniyan ati gbigbé iran eniyan soke.

Ṣugbọn ọpọ isọji aye ode oni fi iyatọ ti o han kedere han si awọn ifihan oore ọfẹ ọrun eyi ti o tẹle iṣẹ awọn iranṣẹ Ọlọrun ni igba atẹyinwa. O jẹ otitọ wipe ifẹ awọn eniyan n pọ si, ọpọlọpọ ni wọn n sọ wipe wọn ti yipada, ọgọọrọ awọn eniyan ni wọn si n lọ si ile ijọsin; sibẹ ayọrisi wọn ko le jẹ ki a gbagbọ wipe idagbasoke wa ninu igbesi aye ẹmi ni tootọ. Ina ti o ru soke fun igba diẹ yoo ku laipẹ, ti okunkun ti yoo tẹle a wa dudu ju ti iṣaaju lọ.

A saba maa n ṣe awọn isọji ti wọn wọpọ ni ode oni lati tẹ ero eniyan lọrun, lati ru ẹmi ọkan wọn soke, lati tẹ ifẹ fun ohun tuntun ti o tun muni tagìrì lọrun. Awọn ọkan ti a ba jere ni ọna yii a ni ifẹ kinkini fun otitọ Bibeli, ifẹ kekere si ẹri awọn woli ati apostoli. Bi ijọsin ko ba dabi eyi ti yoo ru ifẹ wọn soke, wọn ko ni fẹ ni ifẹ si. Wọn ko ni ji giri si iṣẹ iranṣẹ ti o ba nilo ironu ti o jinlẹ. Wọn ko ni tẹti si ikilọ ọrọ Ọlọrun ti o ni i ṣe pẹlu ohun iye ainipẹkun.

Ẹnikẹni ti o ba yipada lootọ, ibaṣepọ pẹlu Ọlọrun ati si ohun iye ainipẹkun ni yoo jẹ koko ọrọ ti o tobi julọ ninu igbesi aye rẹ. Nibo ni

ẹmi ifara-ẹni jin fun Ọlọrun wa ninu awọn ijọ ti wọn gbajugbaja loni? Awọn ti a jere ọkan wọn ko kọ igberaga wọn ati ifẹ aye silẹ. Wọn ko fẹ lati sẹ ara wọn, lati gbe agbelebu, ati lati tẹle Jesu onirẹlẹ, ọlọkan tutu, ju bi wọn ti fẹ ki wọn to ronupiwada lọ. Ẹsin di ohun amuṣere fun awọn alaimọlọrun ati alaigbagbọ nitori pe ọpọ awọn ti n jẹ orukọ rẹ jẹ alaimọkan nipa ẹkọ rẹ. Agbara iwabiọlọrun ti fi ọpọlọpọ ijọ silẹ. Ajọyọ, eré ìtàgé ni ile Ọlọrun, itaja ni ile Ọlọrun, ile ti o rẹwa, ifi ara ẹni han ti lé ero nipa Ọlọrun sẹyin. Ilé ati ọrọ, ati iṣẹ aye ti kun inu ọkan titi ti awọn ohun ti wọn ni i ṣe pẹlu iye ainipẹkun ko fi ni ni akiyesi ti o yẹ.

Laika bi igbagbọ ati ifọkansin ti n rẹwẹsi kaakiri si, awọn atẹle Kristi tootọ ṣi wa ninu awọn ijọ wọnyii. Ki Ọlọrun to bẹ aye yii wo pẹlu idajọ ti o kẹyin, isọji iwabiọlọrun yoo wa laarin awọn eniyan Ọlọrun ni ọna ti a koi tii riri lati igba awọn apostoli wá. A o tu Ẹmi ati agbara Ọlọrun si ori awọn eniyan Rẹ. Ni igba naa, ọpọlọpọ ni yoo ya ara wọn sọtọ kuro ninu awọn ijọ wọnyi ti ifẹ aye yii ti rọpo ifẹ Ọlọrun ati otitọ Rẹ ninu ọkan wọn. Ọpọlọpọ, ati alufa ati awọn eniyan ni yoo fi tayọtayọ gba awọn otitọ nla wọnni ti Ọlọrun jẹ ki a waasu wọn ni akoko yii lati pese awọn eniyan kan silẹ fun wiwa Oluwa lẹẹkeji. Ọta awọn eniyan fẹ lati di iṣẹ yii lọwọ; ki akoko iru ẹgbẹ yii to de, yoo ṣe akitiyan lati di i lọwọ nipa mimu ayédèrú wá. Ninu awọn ijọ wọnyẹn ti o le ko si abẹ agbara itanjẹ rẹ yoo jẹ ki o dabi ẹnipe a tu ibukun Ọlọrun pataki sita; a yoo ri ohun ti a le pe ni ifẹ nla si ọrọ ẹsin. Ọpọlọpọ ni yoo yọ wipe Ọlọrun n ṣe iṣẹ pẹlu iyanu ni aarin wọn, nigba ti iṣẹ naa jẹ ti ẹmi miran. Labẹ aworan ẹsin, Satani yoo wa ọna lati na agbara rẹ si ori awọn Kristẹni.

Ninu ọpọlọpọ awọn isọji ti wọn ṣẹlẹ laarin aadọta ọdun sẹyin, ipa kan naa ni o n ṣiṣẹ, ni ọna ti o kere tabi ti o pọ, eyi a si tubọ fi ara han si ninu awọn ẹgbẹ ti yoo farahan ni ọjọ iwaju. A ri iru irusoke ifẹ ọkan, dida otitọ papọ mọ irọ, eyi ti a ṣe daradara lati ṣini lọna. Sibẹ ko si ẹnikẹni ti o nilo lati di ẹni itanjẹ. Ninu imọlẹ ọrọ Ọlọrun, ko nira lati da ohun ti awọn ẹgbẹ yii jẹ mọ. Nibikibi ti awọn eniyan ba ti kọ ẹri Bibeli silẹ, ti wọn yipada kuro ninu otitọ ti o farahan kedere, ti n dan ọkan wo, eyi ti o nilo iṣẹra ẹni ati kikọ aye silẹ, o yẹ ki a mọ daju wipe Ọlọrun ko le rọ ojo ibukun Rẹ sibẹ. Pẹlu odiwọn ti Kristi funra Rẹ fifunni, "Ẹyin yoo mọ wọn nipa eso wọn" (Matiu 7:16), o han kedere wipe awọn ẹgbẹ wọnyi kii ṣe iṣẹ Ẹmi Ọlọrun.

Ninu otitọ ọrọ Rẹ, Ọlọrun ti fun eniyan ni ifihan ara Rẹ; fun gbogbo awọn ti wọn ba si fẹ gba a, o jẹ aabo kuro lọwọ itanjẹ Satani, kikọ awọn otitọ yii silẹ ni o ṣi ilẹkun fun awọn iwa ẹṣẹ ti wọn wa n tankalẹ ninu ẹsin bayii. A ti gbagbe ohun ti ofin Ọlọrun jẹ ati bi o ti ṣe

pataki to lọna pupọ. Ero ti ko tọna nipa ohun ti ofin jẹ, bi o ti wa titi lae, ati ojuṣe eniyan si ofin mimọ ni o fa aṣiṣe ninu ibaṣepọ wọn pẹlu iyipada ati isọdimimọ, ohun si ni o fa fifa odiwọn ifọkansin wa sisalẹ ninu awọn ile ijọsin. Nibi ni a ti ri aṣiri ohun ti o fa a ti a ko fi ri Ẹmi ati agbara Ọlọrun ninu awọn isọji akoko yii.

Ni ọpọlọpọ awọn orişirişi ijọ, awọn eniyan ti wọn di olokiki nitori ifọkansin wọn ni wọn kiyesi eyi ti wọn si kaanu nitori rẹ. Ọjọgbọn Edwards A. Park, nigba ti o n sọ nipa idamu ẹsin ti o wa ninu rẹ lọwọlọwọ sọ pe: "Ọkan ninu awọn orisun ewu naa ni fifi ori pẹpẹ iwaasu silẹ lati lọ fi ipa muni lati gba ofin Ọlọrun. Ni aye atijọ ori pẹpẹ iwaasu jẹ ìró ohùn ẹri ọkan. . . . Awọn oniwaasu olokiki wa n ṣe iwaasu wọn lójòó nipa titẹle apẹẹrẹ Oluwa, wọn si n gbe ofin ati ilana rẹ, ati ikilọ rẹ ga. Wọn ṣe atunsọ ọrọ meji nla nì, wipe ofin jẹ akọsilẹ iwa pipe Ọlọrun, ati pe ẹnikẹni ti ko ba fẹran ofin ko fẹran iyinrere; nitori ofin ati iyinrere jẹ digi ti o fi bi Ọlọrun ti jẹ nitootọ han. Ewu yii yọri si omiran, ti airi ẹṣẹ ni bi o ti buru to, bi ipa rẹ ti lọ to, ati abuku rẹ. Bi ofin ba ti se tọna to, bẹẹ ni ṣiṣe aigbọran si ti buru to. . . .

"Eyi ti o sunmọ ewu ti a darukọ rẹ tan ni ewu fifi oju tinrin idajọ Ọlọrun. Iwa ti o wọpọ lori pẹpẹ iwaasu iwoyi lati ya idajọ Ọlọrun sọtọ pẹlu aanu Ọlọrun, sọ aanu di ifẹ ọkan lasan dipo ki o gbe e ga gẹgẹ bi ipilẹ ẹkọ ti n muni wùwà. Iṣọwọ-ṣẹtumọ ọrọ Ọlọrun ni ode oni pin ohun ti Ọlọrun ti sopọ niya. Ṣe ofin Ọlọrun jẹ ohun ti o dara abi ohun ti o buru? O jẹ ohun ti o dara. Nitori naa idajọ dara; nitori ti o jẹ ifẹ lati mu ofin ṣe. Lati inu iwa lati maa yẹpẹrẹ ofin ati idajọ Ọlọrun, ewu ti o wa ninu aigbọran eniyan ati bi ipa rẹ ti pọ to, awọn eniyan dede n wu iwa fifi oju tinrin oore ọfẹ ti o pese iwẹnumọ fun ẹṣẹ." Pẹlu eleyi oore ọfẹ padanu iyi ati bi o ti ṣe pataki to ninu iye awọn eniyan, laipẹ laijina wọn ṣetan lati ti Bibeli funra rẹ si ẹgbẹ kan.

Ọpọ awọn olukọ ẹsin loni n sọ wipe Kristi pa ofin rẹ nipasẹ iku Rẹ, nitori naa a ko nilo lati pa a mọ. Awọn kan wa ti wọn fi han gẹgẹ bi eru wuwo, wọn si ṣe agbekalẹ ominira ti wọn n jẹgbadun rẹ ni iyatọ si imunisin ofin.

Ṣugbọn ki i ṣe bi awọn woli ati awọn apostoli ṣe ri ofin Ọlọrun niyi. Dafidi wipe: "Emi a rin ni ominira: nitori ti mo wá ilana Rẹ." O. Dafidi 119:45. Apostoli Jakọbu, ẹni ti o kọwe lẹyin iku Kristi, pe Ofin Mẹwa ni "olu ofin" ati "ofin ominira ti o pe." Jakọbu 2:8; 1:25. Olufihan, ni aadọta ọdun lẹyin ti a kan Jesu mọ agbelebu kede ibukun si ori awọn "ti wọn pa ofin Rẹ mọ, ki wọn le ni ẹtọ si igi iye, ki wọn baa si le gba ẹnu ọna ilu naa wọle." Ifihan 22:14.

Sisọ wipe Kristi pa ofin Baba Rẹ run nipasẹ iku Rẹ ko fẹsẹ mulẹ. Bi o ba jẹ wipe o ṣe e ṣe ki a yi ofin pada tabi ki a kọ ọ silẹ ni, ko ni nilo ki

Kristi ku lati gba eniyan la kuro ninu ẹbi ẹṣẹ. Iku Kristi, dipo ki o pa ofin run, fihan wipe ko ṣe e parun ni. Ọmọ Ọlọrun wá lati wa “gbe ofin ga ki O si mu ki o niyi.” Aisaya 42:21. O sọ pe: “Maṣe ro wipe Mo wa lati pa ofin run;” “titi ti ọrun ati aye yoo fi kọja lọ, kinkini ninu ofin ki yoo kọja lọ.” Matiu 5:17, 18. O sọ nipa ara Rẹ wipe: “Mo ni inu didun lati ṣe ifẹ Rẹ, Ọlọrun Mi: bẹẹ ni, ofin Rẹ wa ninu ọkan Mi.” O. Dafidi 40:8.

Gẹgẹ bi ofin ti wa gan an, ko se e yipada. O jẹ ifihan ifẹ ati iwa Ẹni ti o kọ ọ. Ọlọrun jẹ ifẹ, ofin Rẹ si jẹ ifẹ pẹlu. Ipilẹ nla rẹ ni ifẹ si Ọlọrun ati ifẹ si eniyan. “Ifẹ ni akoja ofin.” Romu 13:10. Iwa Ọlọrun jẹ ododo ati otitọ; bi ofin Rẹ si ti jẹ niyii. Onisaamu sọ wipe: “Otitọ ni ofin Rẹ;” “gbogbo aṣẹ Rẹ jẹ ododo.” O. Dafidi 119:142, 172. Apostoli Pọlu sọ wipe: “Bẹẹ si ni pe mimọ ni ofin, mimọ ni aṣe ati ododo ati didara.” Romu 7:12. Iru ofin yii ti i ṣe afihan ọkan ati ifẹ Ọlọrun nilati wa titi lae gẹgẹ bi Ẹni ti o kọ ọ.

Iṣẹ ironupiwada ati isọdimimọ ni lati ba eniyan laja pẹlu Ọlọrun nipa mimu wọn wà ni ibamu pẹlu ipilẹ ofin Rẹ. Ni atetekọṣe, a da eniyan ni aworan Ọlọrun. O wa ni irẹpọ pipe pẹlu ẹda ati ofin Ọlọrun; a kọ awọn ipilẹ ẹkọ ododo sinu ọkan rẹ. Ṣugbọn ẹṣẹ pin niya pẹlu Ẹlẹda rẹ. Ko le fi aworan Ọlọrun han mọ. Ọkan rẹ wọya ija pẹlu ẹkọ ofin Ọlọrun. “Ero ti ara wa ni iṣọta pẹlu Ọlọrun: nitori ki i ṣe gẹgẹ bi ofin Ọlọrun, oun ko tilẹ le ṣe e.” Romu 8:7. Ṣugbọn “Ọlọrun fẹran araye pupọpupọ ti o fi Ọmọ Rẹ kan ṣoṣo ti O bi funni” ki eniyan le ba Ọlọrun laja. Nipasẹ oore ọfẹ Kristi, a le da pada lati wà ni ibamu pẹlu Ẹlẹda rẹ. Oore ọfẹ ọrun nilati sọ ọkan rẹ di ọtun; o ni lati ni igbe aye tuntun lati oke wa. Iyipada yii ni a n pe ni atunbi, laisi rẹ, Jesu sọ wipe, “ko le ri ijọba Ọlọrun.”

Igbesẹ akọkọ ninu ibalaja pẹlu Ọlọrun ni nini ẹbi ẹṣẹ. “Ẹṣẹ ni riru ofin.” “Nipasẹ ofin ni a fi n ni imọ ẹṣẹ.” 1 Johanu 3:4; Romu 3:20. Lati le ri ẹbi rẹ, ẹlẹṣẹ nilati dan iwa rẹ wo pẹlu odiwọn ododo nla ti Ọlọrun. O jẹ digi ti i fi iwa ododo pipe han ti yoo si ran an lọwọ lati ri ibaku ninu tirẹ. Ofin fi ẹṣẹ eniyan han, ṣugbọn o funni ni atunṣe. Nigba ti o ṣeleri iye fun olugbọran, o kede wipe iku ni ipin olurekọja. Iyinrere Kristi nikan ni o le funni ni ominira kuro ninu idalẹbi tabi isọdi eeri ẹṣẹ. O nilati ni ironupiwada si ọdọ Ọlọrun, ofin Ẹni ti o ru; ati igbagbọ ninu Kristi, ẹbọ imukuro ẹṣẹ rẹ. Bayii ni o gba “imukuro ẹṣẹ ti o ti kọja” o si di alabapin iwa Ọlọrun. O di ọmọ Ọlọrun nigba ti o ba ti gba ẹmi isọdọmọ, nipa eyi ti o kigbe wipe: “Abba, Baba!”

Njẹ o wa wà ni ominira lati ru ofin Ọlọrun bi? Pọlu sọ wipe: “Njẹ a sọ ofin Ọlọrun di asan nipa igbagbọ bi? Ki a ma ri: ṣugbọn, a fi idi ofin mulẹ.” “Bawo ni awa ti a ti di oku si ẹṣẹ ṣe le maa gbe ninu rẹ?” Johanu sọ pẹlu: “Eyi ni ifẹ Ọlọrun, wipe ki a pa aṣẹ Rẹ mọ: awọn aṣẹ

Rẹ ko si nira.” Romu 3:31; 6:2; 1 Johanu 5:3. Ninu atunbi a mu ọkan wà ni ibamu pẹlu Ọlọrun, bi a ti n mu wa ni ibamu pẹlu ofin Rẹ. Nigba ti ayipada nla yii ba ṣẹlẹ ninu ẹlẹṣẹ, o ti kọja lati inu iku lọ si iye, lati inu ẹṣẹ si iwa mimọ, lati riru ofin ati iṣọtẹ si igbọran ati iṣotitọ. Igbe aye atijọ ti iyapa kuro lọdọ Ọlọrun ti pari; igbe aye tuntun ti ibalaja, ti igbagbọ ati ifẹ ti bẹrẹ. Nigba naa ni “ododo ofin” yoo di mimuṣẹ ninu wa, awa ti ko rin ni ipa ti ara, bikoṣe ni ipa ti Ẹmi.” Romu 8:4. Èdè ọkan yoo si jẹ: “Ẹmi ti fẹ ofin Rẹ to! aṣaro mi ni ni gbogbo ọjọ.” O. Dafidi 119:97.

“Ofin Ọlọrun pe, o n yi ọkan pada.” O. Dafidi 19:7. Laisi ofin, awọn eniyan ko le ni oye iwa mimọ ati ailabawọn Ọlọrun tabi ẹbi ati idọti wọn. Wọn ko ni ẹbi tootọ fun ẹṣẹ ati idi fun ironupiwada. Lairi wipe wọn ti sọnu gẹgẹ bi arufin Ọlọrun, wọn ko ni ri wipe wọn nilo ẹjẹ Kristi ti n mu ẹṣẹ kuro. Wọn gba ireti igbala laisi iyipada patapata ninu ọkan tabi atunṣe igbesi aye. Idi niyi ti iyipada lerefe fi wọpọ, ti ọpọ eniyan si n darapọ mọ ijọ ti ko sopọ mọ Kristi.

Awọn ero ti ko tọ nipa isọdimimọ, ti o jade latari ainaani tabi kikọ ofin Ọlọrun silẹ wọpọ laarin awọn ẹgbẹ ẹsin ti akoko naa. Awọn ero wọnyi ko tọna ni ẹkọ bẹẹ si ni wọn lewu lati tẹle; nitori wipe awọn eniyan fi oju rere wo o, o wa jẹ ki o ṣe pataki ki gbogbo eniyan o ni oye ohun ti Iwe Mimọ fi kọni lori koko yii.

Isọdimimọ tootọ jẹ ikọni Bibeli. Apostoli Pọlu ninu lẹta rẹ si ijọ Tẹsalonika sọ wipe: “Eyi ni ifẹ Ọlọrun, ani isọdimimọ yin.” O tun gbadura wipe: “Ki Ọlọrun alaafia funra Rẹ sọ yin di mimọ patapata.” 1 Tẹsalonika 4:3; 5:23. Bibeli fi kọni gedegbe ohun ti isọdimimọ jẹ ati bi a tile ni. Olugbala gbadura fun awọn ọmọlẹyin Rẹ wipe: “Sọ wọn di mimọ pẹlu otitọ Rẹ.” Johanu 17:17. Pọlu si kọni ki “Ẹmi Mimọ” o ya awọn onigbagbọ “si mimọ.” Romu 15:16. Kini iṣẹ Ẹmi Mimọ? Jesu sọ fun awọn ọmọlẹyin Rẹ wipe: “Nigba ti Oun, Ẹmi Otitọ nì ba de, yoo dari yin sinu gbogbo otitọ.” Johanu 16:13. Onisaamu sọ wipe: “Otitọ ni ọrọ Rẹ.” Nipasẹ ọrọ ati Ẹmi Ọlọrun, a ṣi ipilẹ nla ododo tí o wà ninu ofin silẹ fun eniyan. Nigba ti ofin Ọlọrun jẹ “mimọ ati ododo ati didara,” akọsilẹ iwa pipe Ọlọrun, o daju wipe iwa ti a ba wu ni igbọran si ofin naa yoo jẹ mimọ. Kristi ni apẹẹrẹ ti o peye fun iru iwa yii. O sọ wipe: “Mo ti pa aṣẹ Baba Mi mọ.” “Ni igba gbogbo ni mo n ṣe ohun ti o tẹ Ẹ lọrun.” Johanu 15:10; 8:29. Awọn atẹle Kristi nilati dabi Rẹ—nipa oore ọfẹ Ọlọrun lati ni iwa ti o wa ni ibamu pẹlu agbekalẹ ofin mimọ Rẹ. Eyi ni isọdimimọ Bibeli.

Nipa igbagbọ ninu Kristi nikan ni a fi le ṣe eyi, nipasẹ agbara Ẹmi Ọlọrun ti n gbe inu ẹni. Pọlu gba awọn onigbagbọ niyanju wipe: “Ẹ ṣiṣẹ igbala yin yọri pẹlu ibẹru ati iwariri. Nitori Ọlọrun ni O n ṣiṣẹ ninu

yin lati le fẹ ati lati ṣiṣẹ gẹgẹ bi ifẹ inu rere Rẹ.” Filipi 2:12, 13. Kristẹni yoo ni idanwo lati dẹṣẹ, ṣugbọn yoo maa ba jijakadi nigbagbogbo. Nibi ni a ti nilo iranlọwọ Kristi. Ailera eniyan dapọ mọ okun Ọlọrun, igbagbọ si wipe: “Ọpẹ ni fun Ọlọrun, ti O fun wa ni iṣẹgun nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa.” 1 Kọrintin 15:57.

Bibeli fihan kedere wipe iṣẹ isọdimimọ jẹ eyi ti o n tẹsiwaju. Nigba ti ẹlẹṣẹ ba ni alaafia pẹlu Ọlọrun nipa ẹjẹ imukuro ẹṣẹ ni akoko iyipada, igbesi aye Kristẹni ṣẹṣẹ bẹrẹ ni. Ni bayii yoo “tẹsiwaju lọ sinu iwa pipe;” yoo dagba “de iwọn giga ti kikun Kristi.” Pọlu sọ pe: “Ohun kan yii ni mo n ṣe, mo n gbagbe gbogbo ohun atẹyinwa, mo si n naga wo awọn ohun iwaju, emi n lepa lati de opin ire ije ni fun èrè ìpè giga Ọlọrun ninu Kristi Jesu.” Filipi 3:13, 14. Peteru gbe awọn ipele ti a yoo fi ni isọdimimọ ti Bibeli ka iwaju wa: “Pẹlu gbogbo aisinmi, ẹ fi iwa rere kun igbagbọ yin; ati imọ kun iwa rere; ati iwọntuwọnsi kun imọ; ati suuru kun iwọntuwọnsi; ati iwabiọlọrun kun suuru; ati ifẹ ọmọ-ẹnikeji kun iwabiọlọrun; ati ifẹni kun ifẹ ọmọ-ẹnikeji. . . . Bi ẹyin ba ṣe gbogbo ohun wọnyi, ẹyin ki yoo ṣubu lae.” 2 Peteru 1:5—10.

Awọn ti wọn ni iriri isọdimimọ Bibeli yoo fi ẹmi irẹlẹ han. Bi i Mose, wọn ti ri ọlanla iwa mimọ ti o lẹru, wọn si ri aiyẹ wọn ni afiwe pẹlu iwa mimọ ati iwa pipe ti o ga ti Ẹni Ailopin.

Woli Danieli jẹ apẹẹrẹ isọdimimọ tootọ. Igbe aye ọlọjọ pipẹ rẹ kun fun iṣẹ rere fun Oluwa rẹ. O jẹ ẹni ti Ọrun “fẹran jọjọ” (Danieli 10:11). Dipo ki o sọ wipe oun mọ ati pe oun wa ni ailabawọn, woli ti a buyi fun yii ri ara rẹ ni ọkan pẹlu awọn ẹlẹṣẹ tootọ ni Israeli bi o ti n bẹbẹ niwaju Ọlọrun nitori awọn eniyan rẹ: “A ko mu ẹbẹ wa wá siwaju Rẹ nitori ododo wa, ṣugbọn nitori aanu nla Rẹ.” “A ti ṣẹ, a ti wuwa buburu.” O sọ pe: “Mo n sọrọ, mo si n gbadura, mo si tun n jẹwọ ẹṣẹ mi ati ti awọn eniyan mi.” Nigba ti Ọmọ Ọlọrun si farahan, lati fun ni ikilọ, Danieli sọ pe: “Ẹwà mi dibajẹ ninu mi, emi ko si ni okun kan.” Danieli 9:18, 15, 20; 10:8

Nigba ti Jobu gbọ ohùn Ọlọrun lati inu ẹfufu líle, o sọ pe: “Mo korira ara mi, mo si sapamọ sinu erupẹ ati eeru.” Jobu 42:6. Nigba ti Aisaya ri ogo Oluwa, ti o gbọ ti awọn kerubu n kigbe, “Mimọ, mimọ, mimọ ni Oluwa awọn ọmọ ogun,” ni o to kigbe wipe, “Ègbé ni fun mi! nitori ti mo gbé.” Aisaya 6:3, 5. Pọlu, lẹyin ti a gbe lọ si ọrun kẹta ti o si gbọ ohun ti kò ṣe e ṣe ki eniyan o sọ sita, sọ nipa ara rẹ gẹgẹ bi “ẹni ti o kere julọ ninu awọn eniyan mimọ.” 2 Kọrintin 12:2—4; Efesu 3:8. Johanu ẹni ti a fẹran, ti o gbe ori lé àyà Jesu wo ogo Rẹ, o ṣubu bi oku si ẹsẹ angẹli naa. Ifihan 1:17.

Awọn ti wọn n rin ninu ojiji agbelebu Kalfari ko le ni igberaga tabi ifọnu wipe awọn ti bọyọ kuro lọwọ ẹṣẹ. Wọn mọ wipe ẹṣẹ wọn ni o fa

irora ti o fọ ọkan Ọmọ Ọlọrun, ero yii yoo si jẹ ki wọn rẹ ara wọn silẹ. Awọn ti wọn sunmọ Jesu julọ ni wọn ri ailagbara ati ẹṣẹ iran eniyan julọ, ireti kan ṣoṣo ti wọn ni ṣi ni oore ọfẹ Olugbala ti a kan mọgi ti O si jinde.

Isọdimimọ ti o wọpọ ninu ẹsin lode oni ní ẹmi igberaga ati aibikita fun ofin Ọlọrun eyi ti o fihan gẹgẹ bi ajeji si ẹsin Bibeli. Awọn ti wọn n waasu rẹ sọ wipe isọdimimọ jẹ ohun ti o n waye loju ẹsẹ, nipasẹ eyi ti wọn n ni iwa mimọ ti o peye nipa igbagbọ. Wọn sọ pe, "Sa a nigbagbọ, ibukun naa yoo si jẹ tirẹ." Ẹni ti o ba gba a ko ni ohunkohun lati ṣe. Pẹlupẹlu, wọn gbónu si aṣẹ ofin Ọlọrun, wọn n sọ wipe wọn ko ni ojuṣe lati pa ofin mọ. Ṣugbọn njẹ o ṣe e ṣe ki eniyan o jẹ mimọ, ki o wa ni ibamu pẹlu iwa ati ifẹ Ọlọrun, laiwà ni ibamu pẹlu awọn ipilẹ ẹkọ ti i ṣe afihan iwa ati ifẹ Rẹ, ati eyi ti O fẹ han?

Ifẹ fun ẹsin ti o rọrun ti ko nilo ilakaka, isẹra-ẹni, ipinya kuro ninu iwa wèrè aye, ti sọ ikọni nipa igbagbọ, ani igbagbọ nikan di ikọni ti o gbajugbaja; ṣugbọn kini ọrọ Ọlọrun wi? Apostoli Jakọbu sọ wipe: "Èrè kini o jẹ, ẹyin ara mi, bi eniyan ba sọ wipe oun ni igbagbọ ti ko ni iṣẹ? ṣe igbagbọ le gba a la bi? . . . Njẹ iwọ fẹ mọ, olufẹ asán, wipe oku ni igbagbọ laisi iṣẹ bi? Njẹ a ko da Abrahamu baba wa lare nipa iṣẹ bi nigba ti o fi Isaaki ọmọ rẹ rubọ lori pẹpẹ? Njẹ ẹyin ri bi igbagbọ ti ṣiṣẹ pẹlu iṣẹ rẹ, ati pe iṣẹ ni o n sọ igbagbọ di pipe? . . . Nitori naa ẹ wo bi a ti n dá eniyan lare nipa iṣẹ, ki i sii ṣe nipa igbagbọ nikan." Jakọbu 2:14—24.

Ẹri ọrọ Ọlọrun tako ikọni tí n dẹkùn ẹni, ti igbagbọ laisi iṣẹ yii. Ki i ṣe igbagbọ ni o n wa ojurere Ọrun laiṣe awọn ohun ti o yẹ lati le gba aanu, idagbale ni; nitori pe igbagbọ tootọ ni ipilẹ rẹ ninu awọn ileri ati agbekalẹ Iwe Mimọ.

Ki ẹnikẹni maṣe tan ara rẹ jẹ pẹlu igbagbọ wipe wọn le jẹ mimọ nigba ti wọn mọọmọ n ru ọkan ninu ofin Ọlọrun. Ẹṣẹ amọọmọda n pa ẹri ohùn Ẹmi Mimọ lẹnu mọ ni, o si n pin ọkan niya pẹlu Ọlọrun. "Ẹṣẹ ni riru ofin." Ati pe, "ẹnikẹni ti o ba n dẹṣẹ [ru ofin] koi tii ri I, bẹẹ si ni ko mọ Ọ." 1 Johanu 3:6. Lootọ Johanu sọ nipa ifẹ ni ọna kikun ninu awọn episteli rẹ, sibẹ ko lọra lati fihan bi awọn ti wọn n sọ wipe a ti sọ wọn di mimọ nigba ti wọn n ru ofin Ọlọrun ti rí gan an. "Ẹni ti o ba sọ wipe, emi mọ Ọ, ti ko si pa aṣẹ Rẹ mọ, opurọ ni, ko si sí otitọ ninu rẹ. Ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba n pa ọrọ Rẹ mọ, ninu rẹ ni a gbe sọ ifẹ di pípé." 1 Johanu 2:4, 5. Eyi ni a o fi dán ohun ti eniyan ba gbagbọ wo. A ko le sọ wipe ẹnikẹni jẹ mimọ laifi odiwọn iwa mimọ ni ọrun ati ni aye yẹ ẹ wò. Bi eniyan ko ba mọ bi ofin iwa ti ni agbara tó, bi wọn ba fi oju tẹnbẹlu ti wọn ko si ka ilana Ọlọrun si, bi wọn ba ru ọkan ninu eyi ti o kere julọ ninu awọn ofin wọnyi ti wọn si fi kọni, wọn ki yoo niye lori niwaju Ọrun, a yoo si ri wipe ọrọ wọn ko fẹsẹ mulẹ.

Ki eniyan sọ wipe oun wa ni ailẹṣẹ, funra rẹ, jẹ ẹri wipe ẹni ti o n sọ bẹẹ jinna si iwa mimọ. Nitori pe ko ni oye tootọ nipa iwa mimọ ati ailabawọn Ọlọrun tabi ohun ti o yẹ ki awọn ti wọn maa n wa ni iṣọkan pẹlu iwa Rẹ ni; nitori pe ko ni oye tootọ nipa iwa mimọ Kristi ati bi O ti dara to ati bi ẹṣẹ ti buru to, ni eniyan fi le ri ara ni ẹni mimọ. Bi oye rẹ nipa iwa Ọlọrun ati ojuṣe rẹ si ba ti kere to, bẹẹ ni yoo ṣe jẹ olododo to ni oju ara rẹ.

Isọdimimọ ti Iwe Mimọ ṣe alaye kan gbogbo ara—ẹmi ọkan ati ara. Pọlu gbadura fun awọn ara Tẹsalonika pe ki "a pa gbogbo ẹmi ati ọkan ati ara wọn mọ ni ailabawọn titi fi di igba wiwa Jesu Kristi Oluwa wa." 1 Tẹsalonika 5:23. O tun kọwe si awọn onigbagbọ wipe: "Nitori naa mo rọ yin ará nipa aanu Ọlọrun, pe ki ẹ fi ara yin silẹ ni ẹbọ aaye mimọ, ti o jẹ itẹwọgba niwaju Ọlọrun." Romu 12:1. Ni akoko awọn Israeli ni igba atijọ gbogbo ọrẹ ti a mu wa fun irubọ si Ọlọrun ni a n yẹwo finifini. Bi a ba ri abuku kan ni ara rẹ, a ko ni gba a; nitori ti Ọlọrun ti paṣe wipe ki ọrẹ naa o wa "ni ailabawọn." Bẹẹ gẹgẹ ni a ṣe rọ awọn Kristẹni lati fi ara wọn silẹ ni "ẹbọ aaye mimọ ti o jẹ itẹwọgba niwaju Ọlọrun." Lati le ṣe eyi, wọn nilati pa agbara wọn mọ ni ipo ti o dara julọ. Gbogbo iwa ti n ko aarẹ bá okun ara tabi ti ọpọlọ muni kuna lati yẹ fun iṣẹ Ẹlẹda rẹ. Njẹ inu Ọlọrun a dun bi a ba ṣe ohun ti o kere si eyi ti agbara wa le ṣe lọ bi? Kristi sọ wipe: "Ki iwọ ki o fẹran Oluwa Ọlọrun rẹ pẹlu gbogbo ọkan rẹ." Awọn ti wọn fẹran Ọlọrun pẹlu gbogbo ọkan wọn a fẹ lati fun ni iṣẹ ti o dara julọ ninu igbesi aye wọn, latigbadegba ni wọn a si maa wá lati mu gbogbo agbara wọn wà ni ibamu pẹlu awọn ofin ti yoo fi okun fun agbara wọn lati ṣe ifẹ Rẹ. Wọn ki yoo sọ ọrẹ ti wọn mu wa si ọdọ Baba wọn ọrun di alaarẹ tabi eleeri nipa gbigba ara wọn laaye lati jẹ tabi ṣe ohun ti ko fẹ.

Peteru sọ wipe: "Ẹ yago fun ifẹkufẹ ara, eyi ti n ba ọkan jijakadi." 2 Peteru 2:11. Gbogbo itẹra-ẹnilọrun ni ọna ẹṣẹ n sọ agbara eniyan di oku, o si n pa agbara lati ronu ati lati ni oye lori nnkan ti ẹmi, ọrọ tabi Ẹmi Ọlọrun ko le ṣiṣẹ kan lọ titi lori iru ọkan bẹẹ. Pọlu kọwe si awọn ara Kọrintin wipe: "Ẹ jẹ ki a fọ ara wa mọ kuro ninu idọti ti ara ati ti ẹmi, ki a si sọ iwa mimọ di pipe ninu ibẹru Ọlọrun." 2 Kọrintin 7:1. O ri "iwọntuwọnsin" ni ọna kan naa pẹlu awọn eso Ẹmi—"ifẹ, ayọ, alaafia, iwapẹlẹ, iwa rere, iwa tutu." Galatia 5:22, 23.

Pẹlu awọn ọrọ imisi wọnyi, awọn Kristẹni melo ni wọn n sọ ara wọn di alailera nipa lile ọrọ tabi ijọsin ọṣọ ara; awọn melo ni wọn n sọ iwabiọlọrun wọn di ainilari nipa àjẹkì, ọti mimu, nipa faaji ti ko tọ. Dipo ki ijọ o ba iru iwa buburu bayii wi, ni ọpọ igba o n jẹ ki o tẹsiwaju nipa ṣiṣipẹ si ifẹ lati tẹ ara lọrun, lati nifẹ ọrọ tabi ifẹ faaji, lati le fikun iṣura rẹ, eyi ti ifẹ fun Kristi kò lókun lati mú wá. Bi Kristi ba wọ inu

awọn ijọ loni ti O ri ajọyọ ati itaja àìmọ ti a n ṣe nibẹ ni orukọ ẹsin, ṣe ki yoo le awọn olùsọ-ibi-mimọ-di-aimọ naa jade bi o ti le awọn olupa-owó-dà kuro ninu tẹmpili?

Apostoli Jakobu sọ wipe ọgbọn ti o ti oke wá "kọkọ jẹ mimọ." Bi o ba ṣe wipe o ṣe alabapade awọn ti wọn n pe orukọ Jesu ti o ṣeyebiye pẹlu ètè tí tábà ti sọ di eeri, ti eemi ati ara wọn ti di eeri nipasẹ oorun buburu rẹ, ti wọn n ba afẹfẹ ọrun jẹ ti wọn si n fi ipa mu gbogbo awọn ti wọn yi wọn ka lati mí majele yii simu ni—bi o ba ṣe wipe apostoli naa ṣe alabapade ìṣesi ti o tako iwamimọ iyinrere bayii, njẹ ko ni bawi wipe o jẹ "ti aye, ti ifẹkufẹ ara ati ti eṣu?" Ẹrú taba, n sọ wipe oun ni ibukun isọdimimọ patapata, wọn n sọ nipa ireti wọn ni ọrun; ṣugbọn ọrọ Ọlọrun sọ ọ ni kedere wipe "ohun alaimọ kan ki yoo si wọ inu rẹ rara." Ifihan 21:27.

"Njẹ ẹyin ko mọ wipe tẹmpili Ẹmi Mimọ ni ẹyin n ṣe ti o wa ninu yin, eyi ti ẹyin ni lati ọdọ Ọlọrun, ẹyin ki i si i ṣe ti ara yin? nitori ti a ti ra yin ni iye kan: nitori naa ẹ yin Ọlọrun logo ninu ara yin, ati ninu ẹmi yin ti i ṣe ti Ọlọrun." 1 Kọrintin 6:19, 20. Ẹnikẹni ti ara rẹ ba jẹ tẹmpili Ẹmi Mimọ ko ni sọ ọ di ẹrú pẹlu iwa buburu. Ti Kristi ni agbara rẹ n ṣe, Ẹni ti o ra a pẹlu iye owo ẹjẹ, ohun ini rẹ jẹ ti Oluwa. Bawo ni yoo ṣe wa ni ailẹbi bi o ba n na owo ti a fi si ikawọ rẹ ni ina apa? Awọn ti wọn pe ara wọn ni Kristẹni n na owo gọbọi le awọn ohun ti ko nitumọ ti wọn tun le panilara lọdọọdun, nigba ti awọn ọkan n ṣegbe nitori ọrọ iye. A n ja Ọlọrun lole ninu idamẹwa ati ọrẹ, nigba ti iye ti a n ná lori pẹpẹ irubọ ifẹkufẹ ti n panilara ju iye ti a n na lọ fun iranlọwọ awọn alaini tabi fun iranlọwọ iyinrere. Bi gbogbo awọn ti wọn n pe ara wọn ni atẹle Kristi ba wa ni isọdimimọ ni tootọ, dipo ki wọn ná ohun ini wọn lori ohun ti ko nitumọ ti o tun le pani lara, wọn a ko wá sinu ile iṣura Oluwa, awọn Kristẹni a si mu apẹẹrẹ iwọntuwọnsi, iṣẹra-ẹni, ati ifi-ara-ẹni-rubọ lelẹ. Nigba naa ni wọn a jẹ imọlẹ aye.

Aye ti fi ara rẹ fun itẹra-ẹni-lọrun. "Ifẹkufẹ ara, ifẹkufẹ oju, ati igberaga ọkan" n dari ọpọ eniyan. Ṣugbọn awọn atẹle Kristi ni ìpè ti o mọ ju eyi lọ. "Ẹ jade kuro laarin wọn, ki ẹ si da duro, ni Oluwa wi, ki ẹ ma si ṣe fi ọwọ kan ohun aimọ." Ninu imọlẹ ọrọ Ọlọrun a tọna ni sisọ wipe isọdimimọ ko le jẹ otitọ bi ko ba ṣe iṣẹ kikọ lílé ohun ẹṣẹ ati itẹlọrun aye silẹ patapata.

Si awọn ti wọn tẹle agbekalẹ yii, "Ẹ jade kuro ni aarin wọn, ki ẹ si da duro . . . ki ẹ ma si ṣe fi ọwọ kan ohun aimọ," ileri Ọlọrun ni pe, "Emi yoo tẹwọ gba yin, Emi yoo si jẹ Baba fun yin, ẹyin yoo si jẹ ọmọkunrin ati ọmọbinrin Mi ni Oluwa Alagbara wi." 2 Kọrintin 6:17, 18. O jẹ anfani ati ojuṣe fun gbogbo Kristẹni lati ni iriri kikun ninu ohun ti Ọlọrun. Jesu sọ wipe "Emi ni imọlẹ aye." "Ẹni ti o ba tẹle Mi ki

yoo rin ninu okunkun, ṣugbọn yoo ni imọlẹ aye." Johanu 8:12. "Ipa ọna olododo dabi imọlẹ ti n tan, ti o n tan si titi fi di ọjọ pípé." Owe 4:18. Gbogbo igbesẹ igbagbọ ati igbọran n mu ọkan sunmọ Imọlẹ aye si ni, ninu Ẹni ti "ko si okunkun rara." Itansan didan Oorun Ododo n tan sori awọn iranṣẹ Ọlọrun, wọn si nilati jẹ ki o tan sita. Bi awọn irawọ ti n sọ fun wa wipe imọlẹ nla wa ni ọrun, ogo eyi ti n mu wọn tan, bẹẹ gẹgẹ ni o yẹ ki awọn Kristẹni o fihan wipe Ọlọrun wa ni ori itẹ agbaye, Ẹni ti ogo yẹ fun iwa Rẹ, ti a si nilo lati wuwa bii Rẹ. Awọn ẹlẹri Rẹ yoo fi ẹbun Ẹmi Rẹ, iwa mimọ ati ailabawọn iṣesi Rẹ han.

Pọlu, ninu lẹta rẹ si awọn ara Kolose ṣe alaye ibukun nla ti a fun awọn ọmọ Ọlọrun, o sọ pe: A "ko ṣiwọ lati maa gbadura fun yin, ati lati fẹ ki ẹ kun fun imọ ifẹ Rẹ ninu gbogbo ọgbọn ati oye ẹmi; ki ẹyin le maa rin irin ti o yẹ Ọlọrun ninu gbogbo inu didun, ni siso eso ninu gbogbo iṣẹ rere, ti ẹ si n pọ si ninu imọ Ọlọrun, ki ẹ ni okun pẹlu gbogbo ipa, gẹgẹ bi agbara ologo Rẹ, si gbogbo suuru ati ipamọra ati inu didun." Kolose 1:9—11

Ẹwẹ, o kọ nipa ifẹ ọkan rẹ ki awọn arakunrin ni Efesu le ni oye giga nipa anfani Kristẹni. O ṣe alaye fun wọn, ni ọna ti o yeni julọ, agbara iyanu ati imọ ti wọn le ni gẹgẹ bi ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ẹni Giga julọ. Ti wọn ni "lati ní okun pẹlu agbara Ẹmi Rẹ ninu ọkunrin inu," lati "ni gbongbo ki a si fi idi wọn mulẹ ninu ifẹ," lati "ni oye pẹlu gbogbo eniyan mimọ ìbú, ati ìwọn, ati ìjìn, ati gíga; ati lati mọ ifẹ Kristi, ti o ju imọ lọ". Ṣugbọn adura apostoli naa de opin anfani ti o ga julọ nigba ti o n gbadura wipe ki "a le fi gbogbo ẹkun Ọlọrun kun yin." Efesu 3:10—16.

Nibi ni a ti fihan wa bi ipo ti a le de ti ga to nipa igbagbọ ninu awọn ileri Baba wa ọrun, nigba ti a ba ṣe ohun ti O là kalẹ fun wa. Nipasẹ oore ọfẹ Kristi, a ni anfani si itẹ Agbara Ayeraye. "Ẹni ti ko da Ọmọ Oun tikara Rẹ si, ṣugbọn ti O jọwọ Rẹ fun gbogbo wa, yoo ha ti ṣe ti ki yoo fun wa ni ohun gbogbo pẹlu Rẹ lọfẹ?" Romu 8:32. Baba fun Ọmọ Rẹ ni Ẹmi Rẹ lai lo odiwọn, àwa pẹlu le pin ninu ẹkun rẹ. Jesu sọ pe, "Bi ẹyin ti i ṣe eniyan buburu ba mọ bi a ti n fi ẹbun rere fun awọn ọmọ yin: melomelo ni Baba yin ni ọrun yoo ti fi Ẹmi Mimọ Rẹ fun awọn ti n bere lọwọ Rẹ?" Luku 11:3. "Bi ẹyin ba beere ohunkohun ni orukọ Mi, Emi yoo ṣe e." "Beere, ẹyin yoo si ri gba, ki ayọ yin le kun." Johanu 14:14; 16:24.

Nigba ti ìgbé aye Kristẹni nilati kun fun irẹlẹ, ko gbọdọ ni ibanujẹ tabi ibara-ẹni-jẹ. O jẹ anfani fun gbogbo eniyan lati gbe igbe aye debi pe Olorun a fi ọwọ si, yoo si bukun fun. Ki i ṣe ifẹ Baba wa ọrun ni ki a wa labẹ idalẹbi ati okunkun ni gbogbo igba. Ko si ẹmi irẹlẹ tootọ ninu ki a maa rin pẹlu ori ti o tẹba ati ọkan ti o kun fun ero ara

ẹni. A le lọ si ọdọ Jesu fun iwẹnumọ, ki a si duro niwaju ofin laisi itiju tabi ikaanu. “Nitori naa ko si idalẹbi fun awọn ti wọn wa ninu Kristi Jesu, awọn ti ko rin ni ti ara, bikoṣe ni ti Ẹmi.” Romu 8:1.

Nipasẹ Jesu Kristi awọn ọmọ Adamu ti wọn kuna di “ọmọ Ọlọrun.” “A ti Ẹni ti n sọni di mimọ ati awọn ti a n sọ di mimọ jẹ ọkan: idi niyii ti ko fi tiju lati pe wọn ni arakunrin.” Heberu 2:11. Igbe aye Kristẹni nilati jẹ igbe aye igbagbọ, iṣẹgun ati ayọ ninu Ọlọrun. “Olukuluku ẹni ti a ba ti bi nipa ti Ọlọrun ti ṣẹgun aye: eyi si ni iṣẹgun naa ti o ṣẹgun aye, ani igbagbọ wa.” 1 Johanu 5:4. Lootọ ni Nehemaya, iranṣẹ Ọlọrun sọ wipe: “Ayọ Oluwa ni okun yín.” Nehemaya 8:10. Pọlu tun sọ wipe: “Ẹ yọ ninu Oluwa nigba gbogbo: lẹẹkan si mo sọ wipe, Ẹ yọ.” “Ẹ maa yọ nigba gbogbo. Ẹ maa gbadura laisinmi. Ninu ohun gbogbo ẹ maa dupẹ: nitori eyi ni ifẹ Ọlọrun ninu Kristi Jesu nipa yin.” Filipi 4:4; 1 Tẹsalonika 5:16—18.

Awọn eso iyipada ati isọdimimọ Bibeli niyii; nitori wipe awọn Kristẹni ko naani ipilẹ nla fun ododo ti a gbe kalẹ ninu ofin ni awọn wọnyi fi ṣọwọn. Idi niyi ti iṣẹ Ẹmi Ọlọrun ti o wa titi, eyi ti a ri ninu awọn isọji atẹyinwa fi ṣọwọn.

Nipa wiwo ni a fi n yipada. Bi a si ti n kọ awọn ilana mimọ ninu eyi ti Ọlọrun ti fi iwa pipe ati iwa mimọ iṣesi Rẹ han eniyan silẹ, ti iye awọn eniyan si n ṣi si ẹkọ ati ero eniyan, ko yanilẹnu wipe ifọkansin alaaye dinku ninu ijọ. Oluwa sọ wipe: “Wọn ti kọ Mi silẹ orisun omi iye, wọn si ti gbẹ ihò, ihò fifọ, funra wọn ti ko le gba omi duro.” Jeremaya 2:13.

“Alabukunfun ni ẹni naa ti ko rin ninu imọran awọn alaiwabiọlọrun. . . . Ṣugbọn idunnu rẹ wa ninu ofin Oluwa; ninu rẹ ni o n ṣe aṣaro ni ọsan ati ni aṣalẹ. Yoo dabi igi ti a gbin si ipa odo, ti n mu eso rẹ wa ni akoko rẹ; ewe rẹ pẹlu ki yoo yẹ; ohun ti o ba si ṣe, yoo yọri si rere.” O. Dafidi 1:1—3. Ayafi bi a ba da ofin Ọlọrun pada si aaye rẹ ni a to le ri isọji igbagbọ ati iwabiọlọrun ti igba atijọ laarin awọn ti wọn pe ara wọn ni eniyan Rẹ. “Bayii ni Oluwa wi, Ẹ duro loju ọna, ki ẹ si wò, ki ẹ si beere fun oju ọna atijọ, nibi ti ọna rere wa, ki ẹ si rin ninu rẹ, ẹyin yoo si ri isinmi fun ọkan yin.” Jeremaya 6:16.

28

Didojukọ Akọsilẹ Nipa Igbesi Aye

Woli Danieli sọ wipe, “Mo wo o titi ti a fi sọ awọn itẹ kalẹ, ti Ẹnikan ti i ṣe Arugbo Ọjọ si joko: aṣọ Rẹ funfun bi yinyin, irun ori Rẹ si dabi ẹgbọn owu ti o mọ; itẹ Rẹ jẹ ọwọ ina, ayika kẹkẹ Rẹ si jẹ jijo ina. Ọwọ ina n ṣẹyọ o si n tujade lati iwaju Rẹ wa: awọn ẹgbẹrun lọna ẹgbẹrun si n ṣe iranṣẹ fun, ati awọn ẹgbẹẹgbarun lọna ẹgbẹẹgbarun duro niwaju Rẹ: awọn onidajọ joko, a si ṣi awọn iwe silẹ.” Danieli 7:9, 10.

Bayi ni a ṣe fi ọjọ nla ẹlẹru han woli naa nigba ti a o ṣe ayẹwo iwa ati igbesi aye awọn eniyan niwaju Onidajọ gbogbo aye, ti a o si fifun olukuluku “gẹgẹ bi iṣẹ rẹ.” Arugbo Ọjọ nì ni Ọlọrun Baba. Onisaamu sọ wipe: “Ki awọn oke to jade wa, tabi ki iwọ tilẹ to da ilẹ ati aye, ani lati ayeraye, Iwọ ni Ọlọrun.” O. Dafidi 90:2. Oun ti i ṣe orisun gbogbo ẹda, ati orisun gbogbo ofin, ni yoo joko lati ṣe idajọ. Ati awọn angẹli mimọ gẹgẹ bi iranṣẹ ati ẹlẹri ní iye wọn to “ẹgbaarun lọna ẹgbaarun ati ẹgbẹrun lọna ẹgbẹrun,” peju si ibi igbẹjọ nla yii.

“Si kiyesi, ẹnikan ti O dabi Ọmọ eniyan wa pẹlu ikuuku awọsanma, O si wa sọdọ Arugbo Ọjọ, wọn si mu U wa si ẹba Rẹ. A si fun ni agbara ijọba ati ogo ati ijọba, ki gbogbo eniyan, ati orilẹ ede, ati ede le sin in: agbara ijọba Rẹ jẹ ijọba ayeraye, ti ki yoo lopin.” Danieli 7:13, 14. Wiwa Kristi ti a ṣe alaye nibi ki i ṣe wiwa Rẹ sinu aye. O wa si ọdọ Arugbo Ọjọ ni ọrun lati gba agbara ijọba ati ogo ati ijọba, ti a yoo fun ni opin iṣẹ Rẹ gẹgẹ bi Olubalaja. Wiwa yii ki i ṣe wiwa Rẹ lẹẹkeji sinu aye, bikoṣe eyi ti a ṣe asọtẹlẹ rẹ ninu isọtẹlẹ ti yoo ṣẹlẹ ni opin 2300 ọjọ ni 1844. Pẹlu awọn angẹli ọrun, Olu Alufa nla wa wọ inu ibi mimọ julọ nibẹ ni o ti fi ara han niwaju Ọlọrun lati ṣe iṣẹ iranṣẹ Rẹ ti o kẹyin fun eniyan—lati ṣe iṣẹ idajọ iyẹwewo fun gbogbo awọn ti wọn ba yẹ fun anfani rẹ.

Ninu isin ti aye awọn ti wọn ba wa siwaju Ọlọrun pẹlu ironupiwada ati iyipada ọkan, awọn ti a ti ko ẹṣẹ wọn lọ si ibi mimọ nipasẹ ẹjẹ ẹbọ ẹṣẹ nikan ni wọn nipa ninu isin Ọjọ Iwẹnumọ. Bẹẹ gẹgẹ ni ọjọ iwẹnumọ nla ti o kẹyin ati idajọ iyẹwewo awọn ẹjọ ti a o yẹwo nikan ni ti awọn ti wọn jẹ eniyan Ọlọrun. Idajọ awọn awọn eniyan buburu jẹ eyi ti o yatọ patapata, yoo si waye nikẹyin. “Idajọ nilati bẹrẹ ninu ile Ọlọrun: ti o ba kọkọ bẹrẹ pẹlu wa, ki ni yoo jẹ opin awọn ti ko gba iyinrere gbọ? 1 Peteru 4:17.

Awọn iwe akọsilẹ ni ọrun, nibi ti a kọ orukọ ati iṣe awọn eniyan si, ni yoo sọ iru ipinu idajọ. Woli Daniẹli sọ wipe: “Onidajọ joko, a si ṣi awọn iwe silẹ.” Onifihan nigba ti o n ṣe alaye iṣẹlẹ kan naa fikun pe: “A si ṣi iwe miran silẹ, eyi ti i ṣe iwe iye: a si ṣe idajọ awọn oku lati inu awọn ohun ti a kọ sinu awọn iwe wọnni, gẹgẹ bi iṣe wọn.” Ifihan 20:12.

Orukọ gbogbo ẹni ti o ba ti ṣe iṣẹ Ọlọrun ri ni o wa ninu iwe iye. Jesu sọ fun awọn ọmọ ẹyin Rẹ pe: “Ẹ yọ nitori ti a kọ orukọ yin silẹ ni ọrun.” Luku 10:20. Pọlu sọ nipa awọn oṣiṣẹ olootọ, “ti orukọ wọn wa ninu iwe iye.” Filipi 4:3. Daniẹli, nigba ti o woye de, “akoko idamu, ti koi ti i si ri,” sọ wipe a yoo gba awọn eniyan Ọlọrun là, “gbogbo ẹni ti a ba ri orukọ rẹ ninu iwe naa.” Onifihan si sọ fun wa pe kikida awọn ti yoo wọ inu ilu Ọlọrun ni awọn ti “a kọ orukọ wọn sinu iwe iye Ọdọ Aguntan.” Daniẹli 12:1; Ifihan 21:27.

A kọ “iwe iranti” niwaju Ọlọrun, nibi ti a kọ iṣẹ rere “awọn ti wọn bẹru Oluwa, ati awọn ti wọn ronu lori orukọ Rẹ” si. Malaki 3:16. Ọrọ igbagbọ wọn, iṣẹ ifẹ wọn, ni a kọ silẹ ni ọrun. Nehemaya sọ nipa eyi nigba ti o sọ pe: “Ranti mi Ọlọrun mi, . . . ki o ma si ṣe pa iṣẹ rere ti mo ti ṣe fun ile Ọlọrun mi rẹ.” Nehemaya 13:14. Ninu iwe iranti Ọlọrun gbogbo iṣẹ rere ni a kọ silẹ fun iranti titi lae. Gbogbo idanwo ti a kọju ija si, gbogbo iwa ẹṣẹ ti a bori, gbogbo ọrọ pẹlẹ ti a sọ, ni a kọ silẹ patapata. Gbogbo iṣẹ irubọ, gbogbo ijiya ati ibanujẹ ti a farada nitori Kristi, ni a kọ silẹ. Onisaamu sọ wipe: “Iwọ ka irin kiri mi: fi omije mi sinu igo Rẹ: wọn ko ha si ninu iwe Rẹ bi?” O. Dafidi 56:8

Akọsilẹ ẹṣẹ awọn eniyan tun wa pẹlu. “Nitori ti Ọlọrun yoo mu iṣẹ gbogbo wa si idajọ, pẹlu gbogbo ohun ikọkọ, boya rere ni tabi buburu.” “Gbogbo ọrọ asan ti eniyan ba sọ ni yoo jiyin rẹ ni ọjọ idajọ.” Olugbala sọ pe: “Nipa ọrọ rẹ ni a o fi da ọ lare, nipa ọrọ rẹ pẹlu ni a o fi da o lẹbi.” Oniwaasu 12:4; Matiu 12:36, 37. Ète ati erongba ikọkọ wa ninu akọsilẹ ti ko le yẹ; nitori ti Ọlọrun “yoo mu gbogbo ohun ikọkọ ti okunkun wa sinu imọlẹ, yoo si fi gbogbo ero ọkan han sita.” 1 Kọrintin 4:5. “Kiyesi, a ti kọ ọ silẹ niwaju Mi, . . . awọn aiṣedeede rẹ ati aiṣedeede awọn baba rẹ papọ ni Oluwa wi.” Aisaya 65:6, 7.

Gbogbo iṣẹ eniyan ni o n lọ niwaju Ọlọrun a si n kọ ọ silẹ boya si iṣotitọ tabi aiṣotitọ. Niwaju orukọ kọọkan ninu iwe ọrun ni a kọ ọ si ni bi o ti ri gan an gbogbo ọrọ aitọ, gbogbo iwa imọ-ti-ara-ẹni-nikan, gbogbo iṣẹ ti a ko pari, gbogbo ẹṣẹ ikọkọ, pẹlu gbogbo agabagebe. Gbogbo ikilọ tabi ibawi ọrun ti a kọ̀ silẹ, akoko ti a fi ṣofo, anfani ti a ko lo, ipa wa sí rere tabi si buburu, pẹlu atubọtan rẹ ti o lọ jinna réré, gbogbo wọn ni angẹli ti n kọwe silẹ n kọ silẹ. Ọlọgbọn ni sọ wipe: "Bẹru Ọlọrun ki ẹ si pa ofin Rẹ mọ: nitori eyi ni gbogbo ojuṣe eniyan. Nitori ti Ọlọrun yoo mu gbogbo iṣe wa si idajọ." Oniwaasu 12:13, 14. Apostoli Jakọbu gba awọn arakunrin rẹ niyanju wipe: "Ẹ sọrọ bẹẹ ki ẹ si wuwa bẹẹ, bi ẹni ti a o fi ofin ominira da ni ẹjọ." Jakọbu 2:12.

Awọn ti a ba "ka yẹ" ni idajọ yoo nipa ninu ajinde awọn olododo. Jesu sọ wipe: "Awọn ti a o ka yẹ lati gba aye naa ati ajinde lati inu oku, . . . yoo dabi awọn angẹli; wọn jẹ ọmọ Ọlọrun, nitori ti wọn jẹ ọmọ ajinde." Luku 20:35, 36. O tun sọ wipe "awọn ti wọn ṣe rere" yoo jade wa si "ajinde iye." Johanu 5:29. Awọn olododo ti wọn ti ku ki yoo jinde titi di opin idajọ nibi ti a o ti ka wọn yẹ fun "ajinde iye." Nitori naa wọn ki yoo si nibi igbẹjọ funra wọn nigba ti a ba n yẹ iwe wọn wo ti a si n ṣe ipinu lori ẹjọ wọn.

Jesu yoo farahan bi alagbawi wọn, lati bẹbẹ fun wọn niwaju Ọlọrun. "Bi ẹnikẹni ba dẹṣẹ, a ni alagbawi kan pẹlu Baba, Jesu Kristi olododo." 1 Johanu 2:1. "Nitori Kristi ko wọ ibi mimọ ti a fi ọwọ kọ, eyi ti n ṣe apẹẹrẹ ti otitọ; ṣugbọn sinu ọrun funra rẹ, ni akoko yii lati fi ara han niwaju Ọlọrun fun wa." "Nitori naa O le gba wọn la titi de opin awọn ti wọn ba wa si ọdọ Ọlọrun nipasẹ Rẹ, nitori ti O wa laaye titi lae lati bẹbẹ fun wọn." Heberu 9:24; 7:25.

Bi a ti ṣi awọn iwe akọsilẹ silẹ ni idajọ, gbogbo igbesi aye awọn ti wọn gbagbọ ninu Jesu wa siwaju Ọlọrun. Bẹrẹ pẹlu awọn ti wọn kọkọ gbe ori ilẹ aye, Alagbawi wa, gbẹjọ wọn ni iran iran, O wa pari rẹ pẹlu ti awọn alaaye. A darukọ gbogbo eniyan, a si ṣe ayẹwo gbogbo ẹjọ finifini. A gba orukọ wọle, a kọ awọn orukọ kan silẹ. Nigba ti ẹṣẹkẹṣẹ ba ṣi wa ninu iwe akọsilẹ, ni aironupiwada kuro ninu rẹ, ti a ko si dari rẹ ji, a o yọ orukọ wọn kuro ninu iwe iye, a o si pa akọsilẹ iṣẹ rere wọn rẹ kuro ninu iwe iranti Ọlọrun. Oluwa sọ fun Mose wipe: "Ẹnikẹni ti o ba ṣẹ si Mi, oun ni Emi yoo pa orukọ rẹ rẹ kuro ninu iwe Mi." Ẹksodu 32:33. Woli Isikiẹli tun sọ wipe: "Nigba ti olododo ba yi kuro ninu ododo rẹ, ti o dẹṣẹ, . . . a ki yoo sọ nipa gbogbo ododo ti o ti ṣe." Isikiẹli 18:24.

Gbogbo awọn ti wọn ronupiwada kuro ninu ẹṣẹ wọn nitootọ, ti wọn ti gba ẹjẹ Kristi gẹgẹ bi ẹbọ ẹṣẹ wọn nipa igbagbọ, ti wọn ti kọ idariji si ori orukọ wọn ninu iwe ọrun, niwọn igba ti wọn ti di alabapin ododo Kristi, ti iwa wọn si wa ni ibamu pẹlu ofin Ọlọrun, a

yoo mu ẹṣẹ wọn kuro, a yoo si ka wọn yẹ fun iye ainipẹkun. Oluwa sọ nipasẹ woli Aisaya wipe: “Emi, ani Emi, ni O n mu irekọja rẹ kuro nitori Mi, Emi ki yoo si ranti ẹṣẹ rẹ mọ.” Aisaya 43:25. Jesu sọ wipe: “Ẹni ti o ba ṣẹgun, oun naa ni yoo wọ aṣọ funfun; Emi ki yoo si pa oruko rẹ rẹ kuro ninu iwe iye, ṣugbọn Emi yoo jẹwọ rẹ ati orukọ rẹ niwaju Baba Mi ati niwaju awọn angẹli Rẹ.” “Ẹnikẹni ti yoo ba jẹwọ Mi niwaju eniyan, oun ni Emi yoo jẹwọ rẹ niwaju Baba Mi ti n bẹ ni ọrun. Ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba sẹ Mi niwaju awọn eniyan, oun ni Emi yoo sẹ niwaju Baba Mi ti n bẹ ni ọrun.” Ifihan 3:5; Matiu 10:32, 33.

Ifẹ jijinlẹ ti eniyan n fihan ninu awọn ipinu ibi igbẹjọ aye fihan lerefe ifẹ ti a fihan ni gbọngan ọrun nigba ti a ba ṣe ayẹwo awọn orukọ ti wọn wa ninu iwe iye niwaju Onidajọ gbogbo aye. Alagbawi ọrun n bẹbẹ wipe ki a dari ẹṣẹ awọn ti wọn ba ti ṣẹgun nipa igbagbọ ninu ẹjẹ Rẹ ji, pe ki a da wọn pada si ile Edẹni wọn, ki a si de wọn ni ade gẹgẹ bi ajumọjogun “ijọba akọkọ” pẹlu Rẹ. Mika 4:8. Satani, ninu akitiyan rẹ lati tannije ati lati dán iran wa wò ti ro lati sọ erongba Ọlọrun ni dida eniyan di asan; ṣugbọn Kristi, ni akoko yii, wa n beere wipe ki a mu eto naa ṣe afi bi ẹnipe eniyan ko ṣẹ ri. Ko beere idariji ati idalare fun awọn eniyan Rẹ ni kikun ati ni pipe nikan, ṣugbọn ipin ninu ogo Rẹ ati aaye lori itẹ Rẹ.

Nigba ti Jesu n bẹbẹ fun awọn ti wọn gba oore ọfẹ Rẹ, Satani n fi ẹsun kan wọn niwaju Ọlọrun gẹgẹ bi arufin. Atannije nla n wa lati dari wọn sinu aigbagbọ, lati jẹ ki wọn padanu igboya wọn ninu Ọlọrun, lati pin wọn niya kuro ninu ifẹ Rẹ, ki wọn si rú ofin Rẹ. Bayii o tọka si akọsilẹ igbesi aye wọn, si abuku inu iwa wọn, ọna ti wọn ko gba jọ Kristi, eyi ti o ko abuku ba Olurapada wọn, si gbogbo ẹṣẹ ti o dan wọn wo lati da, nitori awọn nnkan wọnyi o pe wọn ni ọmọ ijọba rẹ.

Jesu ko ṣe awawi fun wọn nitori ẹṣẹ wọn, ṣugbọn O fi ironupiwada ati igbagbọ wọn han, O si beere idariji ẹṣẹ fun wọn, O gbe ọwọ Rẹ ti a palara soke niwaju Baba ati awọn angẹli mimọ, O n wipe: Mo mọ wọn pẹlu orukọ wọn, Mo ti kọ wọn si atẹlẹwọ Mi. “Ẹbọ Ọlọrun ni irobinujẹ ọkan, irora aya, Ọlọrun oun ni Iwọ ki yoo gan.” O. Dafidi 51:17. A wa sọ fun olufisun awọn eniyan Rẹ wipe: “Oluwa ba ọ wi, Satani; ani Oluwa ti O yan Jerusalẹmu ba ọ wi: eyi ki ha ṣe ẹka ti a yọ kuro ninu ina bi?” Sekaraya 3:2. Kristi yoo wọ awọn ti wọn jẹ olooto si pẹlu ododo Rẹ, ki O le mu wọn wa si ọdọ Baba Rẹ “bi ijọ ologo ti ko ni abawọn tabi ibajẹ, tabi awọn nnkan bawọnni.” Efesu 5:27. Orukọ wọn duro ninu iwe iye, a si kọ nipa wọn wipe: “Wọn yoo rin pẹlu Mi ninu aṣọ funfun: nitori ti wọn yẹ.” Ifihan 3:4.

Nigba naa ni a o ri imuṣẹ ni kikun ileri majẹmu tuntun. “Emi yoo dari aiṣedeede wọn ji, Emi ki yoo si ranti ẹṣẹ wọn mọ.” “Ni awọn ọjọ

naa ati ni akoko naa, ni Oluwa wi, a yoo wa aiṣedeede Israeli, a ki yoo si ri, ati ẹṣẹ Judah, a ki yoo si ri wọn." Jeremaya 31:34; 50:20. "Ni ọjọ naa ni ẹka Oluwa yoo ni ẹwa ati ogo, eso ilẹ yoo si ni ọla, yoo si dara fun awọn ti o sa asala ni Israeli. Yoo si ṣe wipe, ẹni ti a fi silẹ ni Sioni, ati ẹni ti o kù ni Jerusalẹmu ni a o pe ni mimọ, ani orukọ olukuluku ẹni ti a kọ pẹlu awọn alaaye ni Jerusalẹmu." Aisaya 4:2, 3.

A yoo pari iṣẹ idajọ iyẹwewo ati pipa ẹṣẹ rẹ ṣaaju wiwa Oluwa lẹẹkeji. Nigba ti o jẹ wipe a yoo ṣe idajọ awọn oku lati inu awọn ohun ti a kọ sinu iwe, a ko le pa ẹṣẹ eniyan rẹ titi fi di opin idajọ nigba ti a o ṣe ayẹwo ẹjọ wọn. Ṣugbọn apostoli Peteru sọ ọ ni kedere wipe a yoo pa ẹṣẹ awọn onigbagbọ rẹ "nigba ti akoko itura ba de lati iwaju Oluwa; yoo si ran Jesu Kristi." Iṣe Apostoli 3:19, 20. Nigba ti idajọ iyẹwewo ba pari, Kristi yoo wa, èrè Rẹ yoo si wa pẹlu Rẹ lati fifun olukuluku bi iṣẹ rẹ yoo ti ri.

Ninu isin ti aye lẹyin ti olu alufa ba pari iwẹnumọ ẹṣẹ fun Israeli tan, yoo jade wa yoo si bukun fun ijọ eniyan. Bẹẹ gẹgẹ ni Kristi ni opin iṣẹ Rẹ gẹgẹ bi Olubalaja, yoo farahan, "laisi ẹṣẹ si igbala" (Heberu 9:28), lati bukun awọn eniyan Rẹ ti n duro pẹlu iye ainipẹkun. Ni mimu ẹṣẹ kuro ninu ibi mimọ, bi alufa ti n jẹwọ wọn si ori ẹran iya, bẹẹ gẹgẹ ni Kristi yoo ko gbogbo ẹṣẹ wọnyi si ori Satani, olupilẹṣẹ ẹṣẹ ati amunisẹ. A ran ẹran iya lọ si "ilẹ ti a ko tẹdo" pẹlu ẹṣẹ Israeli lọrun (Lefitiku 16:22); bẹẹ gẹgẹ ni Satani, pẹlu ẹbi gbogbo ẹṣẹ ti o mu ki awọn eniyan Ọlọrun o da, a yoo se mọ inu aye yii fun ẹgbẹrun ọdun kan, nigba naa aye yoo wa ni ahoro, laisi olugbe, nikẹyin yoo jiya ẹbi ẹṣẹ ni kikun ninu ina ti yoo pa awọn eniyan buburu run. Eto irapada nla yoo wa si imuṣẹ ninu iparun ẹṣẹ nikẹyin ati idande awọn ti wọn fẹ lati kọ ẹṣẹ silẹ.

Ni akoko ti a yan fun idajọ—opin 2300 ọjọ ni 1844—iṣẹ iyẹwewo ati ìpa ẹṣẹ rẹ́ bẹrẹ. Gbogbo eniyan ti o ba ti gba orukọ Kristi gbọ ri ni yoo la ayẹwo finifini kọja. Ati oku ati alaaye ni a o ṣe idajọ wọn "lati inu awọn ohun ti a kọ sinu iwe, gẹgẹ bi iṣẹ wọn."

Ẹṣẹ ti a ko ba ronupiwada kuro ninu rẹ, ti a ko si kọ silẹ ko ni ni idariji a ki yoo si pa a rẹ kuro ninu iwe akọsilẹ, ṣugbọn yoo tako ẹlẹṣẹ naa ni ọjọ Ọlọrun. O le wu iwa buburu rẹ ni ọsan gangan tabi ninu okunkun; ṣugbọn wọn han kedere niwaju Ẹni ti a n ba lò. Awọn angẹli Ọlọrun wa ni ibi ti a ti da ẹṣẹ kọọkan ti wọn si n kọ ọ silẹ sinu iwe ti ko le baku. A le fi ẹṣẹ pamọ, ki a sẹ wipe a da ẹṣẹ, ki a paamọ kuro ni oju baba, iya, iyawo, awọn ọmọ ati ojulumọ; o le jẹ awọn ti wọn jẹbi ẹṣẹ nikan ni wọn ni imọlara iwa buburu wọn; ṣugbọn o han gbangba niwaju awọn ti n bẹ ni ọrun. Okunkun oru ọganjọ, aṣiri ọgbọn ẹwẹ itanjẹ ko to lati bo ero kan mọlẹ kuro ninu imọ Ẹni Ainipẹkun. Ọlọrun

ni akọsilẹ ti o peye nipa gbogbo iwa ti ko tọ, gbogbo ìbálò ti ko bojumu. Afarawe iwa ifọkansin ko le tan An jẹ. Ki i ṣe aṣiṣe nipa bi iwa eniyan ti ri. Awọn eniyan ti ọkan wọn ko mọ le tan awọn eniyan jẹ, ṣugbọn Ọlọrun ri gbogbo iboju, O si mọ iwa inu lọhun.

Ero naa ti banilẹru to! Bi ọjọ ti n gori ọjọ, to n di ayeraye ni wọn n gbe ẹru akọsilẹ wọn wọ inu iwe ọrun. Ọrọkọrọ ti a ba ti sọ, ohunkohun ti a ba ti ṣe ko ṣe e pè pada mọ. Awọn angẹli ti ṣe akọsilẹ ati rere ati buburu. Alagbara julọ lori ilẹ aye ko le pe akọsilẹ ọjọ kan ṣọṣọ pada. Iṣe wa, ọrọ wa ani erongba inu ibi kọlọfin ọkan wa, gbogbo wọn ni wọn ni ipa ti wọn lati kó ninu ipinu atubọtan wa si rere tabi si ibi. Bi o tilẹ jẹ wipe a le gbagbe wọn, sibẹ wọn a ṣe ijẹri wọn lati ṣe idalare tabi idalẹbi.

Gẹgẹ bi ayaworan ti n yaworan ẹni si oju pátákó rẹ laiṣe aṣiṣe, bẹẹ gẹgẹ ni a ṣe akọsilẹ pipe nipa iwa eniyan ninu iwe loke. Sibẹ àníyàn wa ti kere to nipa akọsile ti awọn olugbe ọrun yoo ri. Bi a ba le ṣi iboju ti o pin aye yii ati aye airi niya, ti awọn ọmọ eniyan si ri angẹli bi o ti n kọ gbogbo ọrọ ati iṣe eyi ti wọn yoo ba pade ni idajọ silẹ, ọpọlọpọ ọrọ ti wọn n sọ lojoojumọ ni wọn ki yoo sọ jade, ọpọlọpọ ohun ni wọn ki yoo ṣe.

Gbogbo bi a ti lo ẹbun wa ni a yoo ṣe ayẹwo rẹ finifini ni idajọ. Bawo ni a ṣe lo ẹbun ti Ọrun fifun wa? Njẹ Oluwa yoo gba tirẹ nigba wiwa Rẹ pẹlu èlé bi? Njẹ a lo agbara ti a fifun wa, ti owó, ti ọkan, ati ti ọpọlọ, si ogo Ọlọrun ati si ibukun aye yii bi? Bawo ni a ṣe lo akoko wa, kalamu wa, ohùn wa, owó wa, ipa wa? Kini a ṣe fun Kristi lara awọn otoṣi, awọn ti iya n jẹ, awọn alailobi tabi awọn opó? Ọlọrun ti fun wa ni ọrọ mimọ Rẹ; kini a ṣe pẹlu imọlẹ ati otitọ ti a fun wa lati gbọn si igbala? Ifẹnu lasan jẹwọ igbagbọ ninu Kristi ko niyelori; ifẹ ti a fihan nipa iṣẹ nikan ni a ri ni ojulowo. Sibẹ ifẹ nikan ni o le mu ki iṣẹkiṣẹ o ni itumọ niwaju Ọrun. Ohunkohun ti a ba ṣe lati inu ifẹ, bi o tile wu ki o kere ni oju eniyan, Ọlọrun gba a, a si san an lẹsan.

Imọ-ti-ara-ẹni-nikan eniyan ti o farasin han kedere ninu awọn iwe ọrun. Nibẹ ni a ṣe akọsilẹ ojuṣe wọn fun ẹnikeji wọn ti wọn ko pari, bi wọn ti ṣe gbagbe ojuṣe wọn fun Olugbala. Nibẹ ni wọn a ti ri bi wọn ti saba maa n fun Satani ni akoko, ero ati agbara ti o jẹ ti Kristi. Akọsilẹ ti awọn angẹli n gbe lọ si ọrun jẹ eyi ti o banininujẹ. Awọn ẹda ti wọn le ronu, awọn atẹle Kristi, wọn jọwọ ara wọn silẹ fun kiko ohun aye jọ tabi igbadun faaji aye. Owo, akoko, ati okun ṣofo nitori aṣehan ati itẹra-ẹni-lọrun; ṣugbọn akoko perete ni wọn fi silẹ fun adura, fun wiwa Iwe Mimọ, fun rirẹ ọkan silẹ ati ijẹwọ ẹṣẹ.

Satani n mu ọpọlọpọ ète wá lati gba ọkan wa ki o ma baa le ronu lori iṣẹ eyi ti o yẹ ki a mọ julọ. Olutannijẹ nla naa korira otitọ nla ti o

ṣe afihan irubọ ti o mu ẹṣẹ kuro ati olubalaja ti o ni gbogbo agbara. O mọ wipe nipa ti oun, ohun gbogbo duro lori yiyi ọkan awọn eniyan pada kuro ni ọdọ Jesu ati otitọ Rẹ.

Awọn ti wọn ba fẹ ni ipin ninu anfani ibalaja Olugbala ko gbọdọ jẹ ki ohunkohun o di ojuṣe wọn lọwọ lati sọ iwa mimọ di pípé ninu ibẹru Ọlọrun. Dipo ki a lo awọn akoko iyebiye fun faaji, aṣehan, tabi wíwá èrè, a nilati lo o fun kikọ ẹkọ ọrọ otitọ tọkantọkan pẹlu adura. O yẹ ki awọn eniyan Ọlọrun o ni oye ti o yè kooro nipa koko ọrọ ibi mimọ ati idajọ iyẹwewo. Gbogbo eniyan ni wọn nilo fun ara wọn imọ nipa ipo ati iṣẹ Olu Alufa nla wọn. Bi ko ba ri bẹẹ wọn ko ni le lo igbagbọ ti o ṣe pataki fun akoko yii tabi duro ni ipo ti Ọlọrun ti ṣeto fun wọn. Olukuluku ni o ni ọkan lati gbala tabi lati padanu. Olukuluku ni o ni ẹjọ niwaju itẹ idajọ Ọlọrun. Olukuluku ni yoo pade Adajọ lojukoju. O ti wa ṣe pataki to, nigba naa, ki olukuluku o ronu loorekoore lori ìrí ti o leru nigba ti awọn onidajọ yoo joko, ti a yoo si ṣi awọn iwe, nigba ti, pẹlu Danieli, olukuluku yoo duro ni ipo rẹ ni opin ọjọ.

Gbogbo awọn ti wọn ti gba imọlẹ lori awọn koko ọrọ wọnyi ni wọn nilati ṣe ijẹri awọn otitọ nla ti Ọlọrun ti fifun wọn. Ibi mimọ ni ọrun jẹ aaringungun iṣẹ Kristi fun eniyan. O kan gbogbo ẹni ti n gbe ori ilẹ aye. O ṣe afihan eto irapada, ti o gbe wa de opin akoko ti o si fi awọn koko ọrọ iṣẹgun ti ijakadi laarin ododo ati ẹṣẹ han. O ṣe pataki jọjọ ki gbogbo eniyan o ṣe ayẹwo awọn koko ọrọ wọnyi daradara ki wọn sile da ẹnikẹni ti o ba beere lọwọ wọn fun ireti ti o wa ninu wọn lohun.

Ibalaja Kristi ninu ibi mimọ loke ṣe pataki si eto igbala gẹgẹ bi iku Rẹ lori agbelebu ti ṣe. Nipa iku Rẹ, O bẹrẹ iṣẹ ti O goke lọ si ọrun lati lọ pari lẹyin ajinde Rẹ. Nipa igbagbọ, a nilati wọ inu aṣọ ikele lọ, “nibi ti aṣaju wa ti wọ lọ fun wa.” Heberu 6:20. Nibẹ ni imọlẹ lati ara agbelebu Kalfari ti n tan jade. Nibẹ ni a ti le ni oye ti o yè kooro si nipa ohun ijinlẹ irapada. Ọrun pari igbala eniyan pẹlu ohun ti a ko le diye le; irubọ ti a ṣe dọgba pẹlu ohun ti ofin Ọlọrun ti a tẹloju n beere fun. Jesu ti ṣi ọna ti o lọ si itẹ Baba silẹ, ati nipasẹ ibalaja Rẹ ifẹ ọkan tootọ gbogbo ẹni ti o ba wa si ọdọ Rẹ ninu igbagbọ ni a o gbe wa siwaju Ọlọrun.

“Ẹni ti o ba bo ẹṣẹ rẹ mọlẹ ki yoo ṣe rere: ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba jẹwọ ti o si ko wọn silẹ yoo ri aanu gba.” Owe 28:13. Bi gbogbo awọn ti wọn n fi ibaku wọn pamọ, ti wọn ṣe awawi nitori ibaku wọn ba ri bi Satani ti n yọ lori wọn, bi o ti n kẹgan Kristi ati awọn angẹli mimọ nitori iwa wọn, wọn yoo yara kankan lati jẹwọ ẹṣẹ wọn ati lati kọ wọn silẹ. Nipa ibaku ninu iwa, Satani n ṣiṣẹ lati ṣe akoso gbogbo iye eniyan, o si mọ wipe bi a ba fẹran awọn ibaku wọnyi, oun yoo ṣe aṣeyege. Nitori

naa o n ṣiṣẹ lati tan awọn atẹle Kristi jẹ pẹlu ọgbọn arekereke buburu rẹ ki o ma baa ṣe e ṣe fun wọn lati bori. Ṣugbọn Jesu n bẹbẹ fun wọn pẹlu ọwọ Rẹ ti a ṣa lọgbẹ, ara Rẹ ti a pa; O si sọ fun gbogbo ẹni ti yoo tẹle wipe: “Oore ọfẹ Mi to fun ọ.” 2 Kọrintin 12:9. “Ẹ gba ajaga Mi si ọrun yin, ki ẹ si kẹkọ latọdọ Mi; nitori ti Mo jẹ ọlọkan tutu ati onirẹlẹ ni ọkan: ẹyin yoo si ri isinmi fun ọkan yin. Nitori ti ajaga Mi rọrun, ẹru Mi si fuyẹ.” Matiu 11:29, 30. Ki ẹnikẹni maṣe ri ibaku rẹ gẹgẹ bi eyi ti ko le wosan. Ọlọrun yoo funni ni igbagbọ ati oore ọfẹ lati bori wọn.

Ni akoko yii, a n gbe ni ọjọ nla ti iwẹnumọ. Ninu isin ti aye, nigba ti olu alufa ba n ṣe etutu fun Israeli, gbogbo wọn ni a fẹ ki wọn jẹ ọkan wọn niya nipa ironupiwada ẹṣẹ ati irẹra ẹni silẹ niwaju Oluwa, ki a ma baa gé orukọ wọn kuro laarin awọn eniyan. Ni ọna kan naa, gbogbo awọn ti wọn ba fẹ ki orukọ wọn o wa ninu iwe iye nilati, ninu ọjọ perete ti o ku ninu akoko oore ọfẹ wọn, jẹ ọkan wọn niya niwaju Ọlọrun nipa kikaanu fun ẹṣẹ ati ironupiwada tootọ. A nilati ṣe ayẹwo ọkan pẹlu otitọ. Ẹmi ainikanṣe ti o wọpọ laarin ọpọlọpọ Kristẹni ni a nilati kọ silẹ. Ijakadi gbigbona wa niwaju gbogbo awọn ti wọn ba fẹ tẹri iwa buburu ti n jijadu fun akoso ba. Iṣẹ imurasilẹ jẹ ohun ti olukuluku nilati ṣe. A ko ni gbàwálà lẹlẹgbẹjẹgbẹ. Iwa mimọ ati ifọkansin ẹnikan ko ni wulo fun aini ẹlomiran. Bi o tilẹ jẹ wipe gbogbo orilẹ ede ni yoo la idajọ kọja niwaju Ọlọrun, sibẹ yoo yẹ ẹjọ olukuluku wo finifini a fi bi ẹni pe ko si ẹlomiran laye mọ. A nilati dan gbogbo eniyan wo ki a si ri wọn laini abawọn tabi ibaku tabi iru nnkan bawọnni.

Awọn iṣẹlẹ ti wọn so mọ opin iṣẹ iwẹnumọ ẹṣẹ jẹ eyi ti o banilẹru. Awọn ohun ti o wa ninu rẹ tobi jọjọ. Idajọ n lọ lọwọ ninu ibi mimọ loke. Fun ọpọ ọdun iṣẹ yii n tẹsiwaju. Laipẹ—ko si ẹni ti o mọ bi o ti sunmọle to—yoo kan ẹjọ awọn alaaye. Niwaju Ọlọrun to leru igbesi aye wa yoo jade fun ayẹwo. Ni akoko yii ju gbogbo akoko lọ, o yẹ ki gbogbo ọkan o tẹti si iyanju Olugbala: “Ẹ maa ṣọna ki ẹ si maa gbadura: nitori ti ẹyin ko mọ akoko naa.” Maku 13:33. “Nitori naa bi ẹ ko ba ṣọna, Emi yoo de si yin bi ole, ẹyin ki yoo si mọ akoko ti Emi yoo de si yin.” Ifihan 3:3.

Nigba ti iṣẹ idajọ iyẹwewo ba pari, a yoo ṣe ipinu atubọtan olukuluku fun ìyè tabi fun iku. Igba oore ọfẹ yoo pari ni asiko kiun ṣaaju wiwa Oluwa ninu ikuuku awọsanma. Kristi ninu Ifihan, wo akoko naa ni ọjọ iwaju, sọ pe: “Ẹni ti o ba jẹ alaisootọ, ki o maa jẹ alaisootọ nisọ: ati ẹni ti o ba jẹ alaimọ, jẹ ki o jẹ alaimọ nisọ: ati ẹni ti o ba jẹ olododo, jẹ ki o jẹ olododo nisọ: ati ẹni ti o ba jẹ mimọ, jẹ ki o jẹ mimọ nisọ. Si kiyesi, Emi n bọ kankan: ere Mi si n bẹ pẹlu Mi, lati fifun olukuluku gẹgẹ bi iṣẹ rẹ yoo ti ri.” Ifihan 22:11, 12.

Awọn olododo ati awọn eniyan buburu a ṣi wa laaye lori ilẹ aye pẹlu ara kiku wọn—awọn eniyan a maa gbìn, wọn a maa kọle, wọn a maa jẹ wọn a si maa mu, ti gbogbo wọn ko ni mọ wipe a ti ṣe idajọ ikẹyin ti a ko le yipada ninu ibi mimọ loke. Ki ikun omi to wa, lẹyin ti Noah wọ inu ọkọ, Ọlọrun ti i mọ inu ile, O si ti awọn alaiwabiọlọrun mọ ita; ṣugbọn fun ọjọ meje awọn eniyan, laimọ wipe a ti fi edidi di iparun wọn, tẹsiwaju ninu igbesi aye aibikita ati faaji wọn, wọn n kẹgan ikilọ idajọ ti n bọ. Olugbala sọ wipe, “Bẹẹ gẹgẹ ni wiwa Ọmọ eniyan yoo ri.” Matiu 24:39. Ni idakẹjẹ, laifiyesi gẹgẹ bi ole ọganjọ, bẹẹ ni akoko ipinu ti yoo fi edidi di atubọtan gbogbo eniyan yoo de, ti ipe aanu ko ni kọ si awọn eniyan ti wọn jẹbi mọ.

“Nitori naa ẹ maa ṣọna: . . . ki o ma baa wa lojiji ki o baa yin pe ẹ n sun.” Maku 13:35, 36. Ipo awọn ti wọn ba kaarẹ ni sisọna, ti wọn si yiju si onfa aye a buru jọjọ. Nigba ti awọn onisowo ba gbagbe ara wọn sinu wiwa èrè, nigba ti olufẹ faaji n wọna lati tẹ ara rẹ lọrun, nigba ti ọmọbinrin ọṣọ ara ba n to ohun ọṣọ rẹ—o le jẹ akoko kan naa ni Onidajọ gbogbo aye yoo kede gbolohun pe: ” A ti wọn ọ ninu osuwọn, iwọ ko si to.” Danieli 5:27.

29

Ipilẹṣẹ Iwa Buburu

Si ọpọlọpọ eniyan ibẹrẹ ẹṣẹ ati idi fun wiwa rẹ jẹ orisun iporuuru ọkan nla. Wọn ri iṣẹ ibi, pẹlu ayọrisi rẹ ti o banilẹru—wahala ati isọdahoro, wọn wa n beere bawo ni gbogbo eyi ṣe le maa ṣẹlẹ labẹ iṣakoso Ẹni ti O pọ ni ọgbọn ati agbara ati ifẹ. Eyi jẹ ohun ijinlẹ ti wọn ko le ṣalaye. Ninu ainidaniloju ati iyemeji wọn, oju wọn fọ si otitọ ti o han kedere ninu ọrọ Ọlọrun ti o ṣe pataki fun igbala. Awọn kan wa, ninu iwadi wọn nipa bi ẹṣẹ ṣe wa, ti wọn ṣe akitiyan lati wo inu ohun ti Ọlọrun ko fihan; nitori naa wọn ko ri idahun si iṣoro wọn; awọn ti wọn ni ẹmi iyemeji ati awawi èké ri eyi gẹgẹ bi idi lati kọ ọrọ Iwe Mimọ silẹ. Awọn miran ẹwẹ, wọn baku lati ni oye kikun nipa iṣoro nla ti ibi, nitori pe aṣa ati ìṣi Bibeli tumọ ti ṣokunkun bo ikọni Bibeli nipa iwa Ọlọrun, bi ijọba Rẹ ti ri, ati iwuwasi Rẹ ni didoju kọ ẹṣẹ.

Ko ṣe e ṣe lati ṣe alaye ibẹrẹ ẹṣẹ ni ọna lati funni ni idi fun bi o ṣe wa. Sibẹ, a le ni oye ti o to nipa ibẹrẹ ati opin ẹṣẹ lati le ṣe afihan ni kikun ododo ati aanu Ọlọrun ninu gbogbo iṣesi Rẹ si ibi. Ko si ohun ti a kọni yekeyeke ninu Iwe Mimọ ju eyi pe Ọlọrun kọ ni O mu ẹṣẹ wá; wipe ko ṣa dede fa ọwọ oore ọfẹ Rẹ seyin, ko si ibaku ninu iṣejọba Ọlọrun, ti o wa fa iṣọtẹ. Ẹṣẹ jẹ ohun ti o farahan laipẹ yii, ti a ko si le ṣe alaye wiwa rẹ. O jẹ ijinlẹ, ti a ko le ṣalaye; lati ṣe awawi fun tumọ si wipe a n gbeja rẹ. Bi a ba ri awawi fun, tabi bi a ba ri idi ti o fi yẹ ki o wa, ko ni jẹ ẹṣẹ mọ. Alaye kan ṣoṣo ti a le ṣe nipa rẹ ni eyi ti a funni ninu ọrọ Ọlọrun; o jẹ “riru ofin;” o jẹ ifihan ero ti o n wọya ija pẹlu ofin ifẹ nla eyi ti i ṣe ipilẹ ijọba Ọlọrun.

Ki iwa ibi to wọle, alaafia ati ayọ wa ni gbogbo agbala aye. Ohun gbogbo wa ni irẹpọ pẹlu ifẹ Ẹlẹda. Ifẹ fun Ọlọrun ni o ga ju, ifẹ fun

ẹnikeji si wa ni aisi ojuṣaju. Kristi, Ọrọ naa, Ọmọ bibi kan ṣoṣo Baba, jẹ ọkan pẹlu Baba ayeraye,—ọkan ninu iwalaaye, ninu iwa, ati ninu ero—ẹnikan ṣoṣo ninu gbogbo agbalaaye ti O le mọ gbogbo imọran ati erongba Ọlọrun. Baba da gbogbo ẹda ọrun nipasẹ Kristi. “Nipasẹ Rẹ ni a da ohun gbogbo, ti o wa ni ọrun, . . . ibaajẹ itẹ, tabi agbara ijọba, tabi ijọba oju ọrun, tabi agbara” (Kolose 1:16); gbogbo ọrun si n jọsin Kristi ati Baba bakan naa.

Ofin ifẹ ni o jẹ ipilẹ ijọba Ọlọrun, idunnu gbogbo awọn ohun ti a da duro lori igbọran pipe si ipilẹ nla ododo rẹ. Ọlọrun fẹ iṣẹ ifẹ lati ọdọ gbogbo iṣẹda Rẹ—igbọran ti o wa latari imọriri iwa Rẹ. Ko ni inu didun si fifi ipa muni ṣe igbọran, O si fun gbogbo eniyan ni ominira lati ṣe ipinu, ki wọn ba a le sin In gẹgẹ bi ọkan wọn ti yan.

Ṣugbọn ẹnikan wa ti o yan lati ṣi ominira yii lo. Ẹṣẹ bẹrẹ pẹlu ẹni naa, ti o tẹle Kristi, o jẹ ẹni ti Ọlọrun bu ọla fun julọ, o si ni agbara ati ogo julọ laarin awọn olugbe ọrun. Ṣaaju isubu rẹ, Lusifa jẹ akọkọ ninu awọn kerubu ti n bò, o jẹ mimọ ko si ni abawọn. “Bayii ni Oluwa Ọlọrun wi; Iwọ fi edidi di iye naa, o kun fun ọgbọn, o si pe ni ẹwa. Iwọ ti wa ni Edẹni ọgba Ọlọrun; gbogbo okuta iyebiye ni ibora rẹ. . . . Iwọ ni Kerubu ti a yan ti n bò; Emi ṣi ti ṣe ọ bẹẹ; iwọ wa ni oke mimọ Ọlọrun; iwọ rin soke rin sodo laarin okuta ina. Iwọ pe ni ọna rẹ lati ọjọ ti a ti da ọ, titi ti a fi ri aiṣedeede ninu rẹ.” Isikiẹli 28:12—15.

Lusifa i ba ṣi maa ri oju rere Ọlọrun, ti gbogbo awọn angẹli i ba ṣi fẹran rẹ ti wọn i ba si bọwọ fun, ti oun i ba si maa lo agbara giga rẹ lati bukun awọn eniyan ati lati fi ogo fun Ẹlẹda rẹ. Ṣugbọn woli naa sọ pe, “Ọkan rẹ gbé ga nitori ẹwa rẹ, iwọ ti ba ọgbọn rẹ jẹ nitori didan rẹ.” Ẹsẹ 17. Diẹdiẹ, Lusifa gba ẹmi igberaga laaye. “Iwọ gbe ọkan rẹ ga bi ọkan Ọlọrun.” “Iwọ ti sọ wipe, . . . emi yoo goke kọja ikuuku awọsanma; emi yoo dabi Ẹni Giga Julọ.” Ẹsẹ 6; Aisaya 14:13, 14. Dipo ki o jẹ ki Ọlọrun o ga julọ ninu ifẹ ati igbọran awọn ẹda, ifẹ Lusifa ni lati gba iṣẹ ati ijọsin wọn fun ara rẹ. O ṣe ojukokoro si ọla ti Baba ayeraye fun Ọmọ Rẹ, ọmọ alade awọn angẹli gbero lati ni agbara ti o tọ si Kristi nikan ṣoṣo.

Gbogbo ọrun ni o yọ lati fi ogo Ẹlẹda ati iyin Rẹ han. Nigba ti a ba bu ọla fun Ọlọrun bayii, alaafia ati idunnu yoo wa. Ṣugbọn ohùn orin ti ko bojumu wa ba orin awọn angẹli jẹ bayi. Iṣẹ ati igbe ara ẹni ga, ti o yatọ si erongba Ọlọrun ta ero ibi ji ninu awọn ẹni ti o jẹ wipe ogo Ọlọrun ni o ga ju ninu ọkan wọn. Igbimọ ọrun bẹ Lusifa. Ọmọ Ọlọrun ṣe alaye titobi, didara ati ododo Ẹlẹda, ati bi ofin Rẹ ti jẹ mimọ to ti ko si ṣe e yipada. Ọlọrun funra Rẹ ni o fi idi eto ọrun lelẹ, ni yiyago kuro ninu rẹ, Lusifa a kẹgan Ẹlẹda rẹ, yoo si ko iparun ba ara Rẹ. Ṣugbọn ikilọ ti a ṣe ninu ifẹ ati aanu tilẹ n ru ẹmi atako

soke ni. Lusifa jẹ ki ẹmi owu si Kristi o gba iṣakoso, o wa tubọ n se ọkan rẹ le si.

Igberaga ninu ogo rẹ mu ifẹ fun iṣakoso wa. Lusifa ko ri ọla giga ti a fifun gẹgẹ bi ẹbun Ọlọrun, ko si jẹ ki o fi imoore rẹ han si Ẹlẹda. O ṣogo ninu didan rẹ, o si fẹ lati dọgba pẹlu Ọlọrun. Gbogbo ogun ọrun fẹran rẹ wọn si bọwọ fun. Inu awọn angẹli n dun lati jiṣẹ fun, a si fi ọgbọn ati ogo wọ ọ ni aṣọ ju gbogbo wọn lọ. Sibẹ Ọmọ Ọlọrun ni a mọ gẹgẹ bi Alayeluwa ọrun, ọkan ni agbara ati aṣẹ pẹlu Baba. Ninu gbogbo erongba Ọlọrun, Kristi maa n wa nibẹ, ṣugbọn a ko gba Lusifa laaye lati wọ inu erongba Ọlọrun. Angẹli alagbara yii beere, “Bawo ni Kristi ṣe le jọ ọga? Kilode ti a fi n bọwọ fun ju Lusifa lọ?”

O fi ipo rẹ niwaju Ọlọrun silẹ, Lusifa jade lọ lati tan ẹmi ainitẹlọrun ka laarin awọn angẹli. O ṣiṣẹ ni ọna ikọkọ ti o lagbara, fun igba diẹ o fi erongba rẹ ni pato pamọ labẹ irisi wipe oun n bọwọ fun Ọlọrun, o ṣe akitiyan lati ru ẹmi ainitẹlọrun soke nipa ofin ti o n ṣe akoso awọn olugbe ọrun, o n sọ wipe wọn din ominira wọn ku ni ainidi. O sọ wipe awọn angẹli le ṣe igbọran si ifẹ ọkan wọn niwọn igba ti o ṣe wipe wọn jẹ mimọ. O wa lati ri ikaanu fun ara rẹ nipa fifihan pe Ọlọrun ko ṣe ododo pẹlu oun nipa fifi ọla ti o ga julọ fun Kristi. O sọ wipe ni gbigbero lati ni agbara ati ọla ti o pọ si, ki i ṣe ero oun ni lati gbe ara oun ga, ṣugbọn lati le fun gbogbo awọn olugbe ọrun ni ominira, nipasẹ eyi, wọn a le ni igbesi aye ti o ga si.

Ọlọrun ninu aanu Rẹ fi ara da Lusifa fun igba pipẹ. Ki i ṣe lọgan ti o kọkọ gba ẹmi ainitẹlọrun laaye, tabi nigba ti o gbe ero irọ rẹ kalẹ niwaju awọn angẹli ti wọn jẹ olootọ ni a yọ kuro ninu ipo giga rẹ. Fun igba diẹ a fi aaye gba a ni ọrun. Lati igbadegba ni a ṣeleri idariji fun bi o ba ronupiwada ti o si ṣe igbọran. Iru akitiyan bayi ti ifẹ ati ọgbọn ayeraye le ṣe ni a lo lati fi ibi ti o ti ṣe aṣiṣe ye. Ko si ẹmi ainitẹlọrun ni ọrun tẹlẹ ri. Lusifa funra rẹ ko kọkọ ri ibi ti oun n lọ; ko ni oye ohun ti ero ọkan rẹ jẹ nitootọ. Ṣugbọn bi a ti fi han wipe ko si idi fun ainitẹlọrun rẹ, Lusifa ri wipe oun ṣe aṣiṣe, wipe ohun ti Ọlọrun sọ jẹ otitọ, ati wipe oun nilati sọ eyi niwaju gbogbo ọrun. Bi o ba ṣe eyi ni, i ba ti gba ara rẹ ati ọpọlọpọ awọn angẹli là. Ni akoko yii, koi ti i sọ igbọran rẹ si Ọlọrun nu patapata. Bi o tilẹ jẹ wipe o ti fi ipo rẹ silẹ gẹgẹ bi kerubu ti n bò, sibẹ bi o ba jẹ wipe o fẹ lati pada si ọdọ Ọlọrun, ki o gba ọgbọn Ẹlẹda, ki o si jẹ ki ipo ti a fun oun ninu eto nla Ọlọrun o tẹ oun lọrun, a ba da pada sinu ipo rẹ. Ṣugbọn igberaga ko jẹ ki o tẹriba. O fi agidi gbeja ero rẹ, o sọ wipe oun ko nilo ironupiwada, o wa jọwọ ara rẹ silẹ ni kikun fun ijakadi nla, ni atako si Ẹlẹda rẹ.

Gbogbo agbara ọpọlọ giga rẹ ni o wa n lo lati ṣe iṣẹ itanjẹ, lati le ri ikaanu awọn angẹli ti wọn wa labẹ akoso rẹ. O lo pípè tí Kristi pe e lati

ki i nilọ ati lati gba a niyanju fun ète ọlọtẹ rẹ. Satani sọ fun awọn ti ifẹ wọn fun jẹ ki wọn sunmọ julọ wipe a ko ṣe idajọ oun daradara, wipe a ko bọwọ fun ipo oun ati wipe a fẹ din ominira oun ku. Lati ibi gbigbe ọrọ kalẹ ni ọna ti ko to, o de ibi itanjẹ ati pipa irọ ojukoju, nipa fifi ẹsun kan Ọmọ Ọlọrun wipe o ti pete lati doju ti oun niwaju awọn olugbe ọrun. O wa ọna lati wa ija eke laarin oun ati awọn angẹli ti wọn ṣe otitọ. Gbogbo awọn ti ko le tanjẹ ki o si mu wọn wa si ọdọ rẹ ni kikun ni o fi ẹsun kan wipe wọn ko kọbi ara si alaafia awọn olugbe ọrun. O fi ẹsun iṣẹ ti o n ṣe gan kan awọn ti wọn jẹ olootọ si Ọlọrun. Lati le mu ki ẹsun ti o fi kan Ọlọrun nipa aisododo si o duro, o bẹrẹ si ni i ṣe afihan ọrọ ati iṣesi Ẹlẹda ni ọna ti ko to. Iwa rẹ ni lati damu awọn angẹli pẹlu ọrọ arekereke nipa erongba Ọlọrun. Gbogbo ohun ti o han kedere ni o sọ di ohun ijinlẹ, nipa ọgbọn arekereke, o mu wọn ṣe iyemeji si ọrọ Jehofa ti o han kedere. Ipo giga rẹ, pẹlu bi o ti sunmọ iṣejọba Ọlọrun to, fun ọrọ rẹ lokun, ọpọlọpọ si fẹ lati darapọ mọ ninu iṣọtẹ rẹ si aṣẹ Ọlọrun.

Ọlọrun ninu ọgbọn Rẹ fi aaye gba Satani lati tẹsiwaju ninu iṣẹ rẹ, titi ti ẹmi ainitẹlọrun fi fi ara han di iṣọtẹ nla. O ṣe pataki ki eto rẹ o dagbasoke daradara, ki ohun ti wọn jẹ gan an ati ibi ti wọn yoo jasi le farahan fun gbogbo wọn. A gbe Lusifa ga pupọpupọ gẹgẹ bi kerubu ti n bo; awọn olugbe ọrun fẹran rẹ jọjọ, agbara rẹ lori wọn si pọ. Ki i ṣe awọn olugbe ọrun nikan ni wọn wa ninu ijọba Ọlọrun, bikoṣe ati ti awọn aye ti O da pẹlu; Satani ro wipe bi oun ba le ko awọn angẹli ọrun si ọdọ oun lati ṣọtẹ, oun le ko awọn aye yoku pẹlu. O fi arekereke ro eyi ti o kan an ninu ọrọ naa, nipa lilo ọgbọn ẹwẹ ati irọ lati ri ohun ti o fẹ. Agbara rẹ lati tannijẹ pọ pupọ, ati nipa fifi aṣọ eke bo ara rẹ o ni anfani. Ani awọn angẹli ti wọn ṣegbọran ko ni oye kikun nipa iwa rẹ tabi ri ibi ti iṣẹ rẹ n lọ.

A bu ọla fun Satani pupọpupọ, gbogbo iṣesi rẹ ni o fi juuju bo loju, ti o fi jẹ wipe o nira lati sọ fun awọn angẹli ohun ti iṣẹ rẹ jẹ ni tootọ. Ayafi ti o ba dagba daradara, ẹṣẹ ko ni farahan ni iwa buburu ti o jẹ. Titi di akoko yii, ko ni aaye ninu aye ti Ọlọrun da, awọn ẹda mimọ ko si ni oye bi o ti ri ati bi o ti buru to. Wọn ko le mọ ayọrisi buburu ti yoo jade latari kikọ ofin Ọlọrun silẹ. Ni akọkọ, Satani fi iṣẹ rẹ pamọ sabẹ ifarahan wipe oun n ṣe igbọran si Ọlọrun. O sọ wipe oun n wa lati bu ọla fun Ọlọrun, lati fi idi ijọba Rẹ mulẹ, ati lati wa rere gbogbo awọn olugbe ọrun. Nigba ti o n gbin ainitẹlọrun sinu ọkan awọn angẹli ti wọn wa labẹ rẹ pẹlu ọgbọn arekereke, o mu ki o han wipe oun n fẹ mu ainitẹlọrun kuro. Nigba ti o sọ wipe ki a yi eto ati ofin ijọba Ọlọrun pada, o sọ ọ labẹ ifarahan wipe o ṣe pataki lati le jẹ ki iṣọkan o wa ni ọrun.

Ni didoju ko ẹṣẹ, ododo ati otitọ nikan ni Ọlọrun le lo. Satani le lo ohun ti Ọlọrun ko le lo—irọ ati ẹtan. O n wa lati fi ọrọ Ọlọrun han ni

ọna eke, o si ṣe afihan eto ijọba Rẹ ni ọna ti ko tọ niwaju awọn angẹli, o n sọ wipe Ọlọrun ko ṣe daradara ni ṣiṣe ofin ati ilana fun awọn olugbe ọrun; wipe ni fifẹ ki awọn ẹda Rẹ o tẹriba, ki wọn si ṣe igbọran, O n wa lati gbe ara Rẹ ga lasan ni. Nitori naa a nilati fihan niwaju awọn olugbe ọrun ati awọn aye yoku wipe ijọba Ọlọrun jẹ eyi ti o tọna, ofin Rẹ si pe. Satani jẹ ki o dabi ẹnipe oun funra oun n fẹ rere agbala aye. Iwa tootọ afipa-gba-ohun-ti-ko-tọ si ati afojusun rẹ gan an nilati yé gbogbo wọn. O nilati ni akoko lati fi iwa rẹ han nipa iṣẹ buburu rẹ.

Satani di aisirẹpọ ti iwa rẹ fa ni ọrun le ofin ati iṣejọba Ọlọrun lori. O sọ pe gbogbo iwa buburu ti n ṣẹlẹ waye nitori iṣejọba Ọlọrun. O sọ pe afojusun oun ni lati tun aṣẹ Jehofa ṣe. Nitori naa o ṣe pataki ki o fi ọrọ rẹ han, ki o si fi ayọrisi iru atunṣe ti o fẹ ṣe ninu ofin Ọlọrun han. Iṣẹ rẹ nilati da a lẹbi. Satani kọkọ sọ wipe ki i ṣe wipe oun n ṣọtẹ. Gbogbo agbaye ni yoo ri ti a o fi opurọ naa han.

Ani nigba ti a ṣe ipinu wipe ko le duro ni ọrun mọ, Ọgbọn Ayeraye ko pa Satani run. Niwọn igba ti o jẹ wipe iṣẹ ifẹ nikan ni o le jẹ itẹwọgba lọwọ Ọlọrun, igbọran awọn ẹda Rẹ nilati duro lori igbagbọ wọn ninu iṣotitọ ati aanu Rẹ. Nitori ti awọn olugbe ọrun ati aye yoku koi ti i ṣetan lati mọ ohun ti ẹṣẹ jẹ tabi ayọrisi rẹ, wọn ko le ri ododo ati aanu Ọlọrun ninu pipa Satani run. Bi o ba ṣe wipe lọgan ni a pa run ni, wọn i ba maa sin Ọlọrun lati inu ibẹru dipo ifẹ. A ba ma le pa ipa atannijẹ naa run patapata, bẹẹ si ni a ba ma le ká iṣẹ ẹmi iṣọtẹ kuro nilẹ patapata. A nilati jẹ ki iwa ibi o dagba daradara, ki gbogbo ẹda le ri awọn ẹsun ti o fi kan iṣejọba Ọlọrun ni bi wọn ti ri gan, ki ododo ati aanu Ọlọrun ati iwatiti lae ofin rẹ le wa ni airiwisi titi lae.

Iṣọtẹ Satani yoo jẹ ẹkọ fun gbogbo agbaye lati irandiran ẹri titi lae si iwa ati ayọrisi buburu ẹṣẹ. Iṣọwọṣẹjọ Satani, ipa rẹ lori eniyan ati angẹli yoo fihan ohun ti yoo jẹ eso kikọ aṣẹ Ọlọrun silẹ. Yoo jẹ ẹri wipe a so iṣedeede awọn ẹda Ọlọrun pọ pẹlu iṣejọba ati ofin Rẹ. Bayi itan ifarahan buburu iṣọtẹ yoo jẹ aabo ayeraye fun gbogbo awọn ẹda mimọ, lati maṣe jẹ ki a tan wọn jẹ nipa iwa ẹṣẹ lati gba wọn kuro ninu didẹṣẹ ati jijiya rẹ.

Titi di opin ijakadi naa ni ọrun, afipa-gba-ohun-ti-ko-tọ-si naa si tẹsiwaju lati da ara rẹ lare. Nigba ti a ṣe ikede wipe a o le oun pẹlu awọn abanikẹdun rẹ kuro ni ibi igbadun, nigba naa ni aṣaju iṣọtẹ naa fi igboya fi irira rẹ si ofin Ẹlẹda han. O ṣe atunsọ ọrọ rẹ wipe awọn angẹli ko nilo akoso, ṣugbọn ki a fi wọn silẹ lati tẹle ero ọkan wọn, eyi ti yoo tọ wọn sọna rere lọjọkọjọ. O kọ aṣẹ Ọlọrun silẹ gẹgẹ bi ihamọ fun ominira wọn o si wipe afojusun oun ni lati ri wipe a pa ofin rẹ; wipe ni gbigba wọn kuro ninu ihamọ rẹ, ogun ọrun a bẹrẹ igbesi aye ti o ga ti o si logo julọ.

Pẹlu ohun kan, Satani ati ogun rẹ da Kristi lẹbi patapata fun iṣọtẹ wọn, wọn n sọ wipe ti o ba jẹ wipe a ko ba wọn wi ni, wọn ki ba ti ṣọtẹ. Pẹlu agidi ati orikunkun ninu aigbọran wọn, wọn n ṣa ipa asan lati bi ijọba Ọlọrun wo, sibẹ wọn n sọ pẹlu ọrọ odi wipe wọn jẹ alailẹṣẹ ti n jiya lọwọ agbara aninilara, lẹyin-ọrẹyin, aṣọtẹ nla naa ati awọn ti n ba kaanu kuro ni ọrun.

Iru ẹmi kan naa ti o fa iṣọtẹ ni ọrun ṣi n fa iṣọtẹ ni aye. Satani n lo iru ete kan naa ti o lo pẹlu awọn angẹli pẹlu awọn eniyan. Ẹmi rẹ ni o wa n gbe inu awọn ọmọ alaigbọran. Gẹgẹ bi i tire wọn n wa lati wo aala ti ofin Ọlọrun pa lulẹ ki wọn si ṣe ileri ominira fun eniyan nipa riru awọn ilana rẹ. Biba ẹṣẹ wi ṣi n fa iru ẹmi ikorira ati atako kan naa. Nigba ti iṣẹ iranṣẹ ikilọ Ọlọrun ba wọ inu ọkan eniyan lọ, Satani a dari eniyan lati da ara wọn lare ki wọn si wa ikaanu awọn yoku ninu iwa ẹṣẹ wọn. Dipo ki wọn ṣe atunṣe aṣiṣe wọn, wọn a binu si ẹni ti o ba wọn wi, a fi bi ẹnipe oun nikan ṣoṣo ni o fa wahala. Lati akoko Abeli olododo titi di akoko wa ni a ti n fi iru ẹmi kan naa han si awọn ti n ba ẹṣẹ wi.

Nipa ṣiṣe ifihan iwa Ọlọrun, gẹgẹ bi o ti ṣe ni ọrun, ti o n jẹ ki a ri I gẹgẹ bi ẹni lile ati onroro, Satani mu ki eniyan o dẹṣẹ. Pẹlu aṣeyege yii, o sọ wipe ikilọ Ọlọrun ti ko tọ ni o fa isubu eniyan, gẹgẹ bi o ti fa iṣọte oun.

Ṣugbọn Ẹni Ailopin funra Rẹ kede iwa ara Rẹ: "Oluwa Ọlọrun, alaanu ati oloore ọfẹ, onipamọra, ti o kun fun oore ati otitọ, ti o n pa aanu mọ fun ẹgbẹẹgbẹrun, ti o n dari aiṣedeede ji ati irekọja ati ẹṣẹ, ti ki yoo si jẹ ki ẹlẹbi o lọ laijiya." Eksodu 34:6, 7.

Ni lile Satani kuro ni ọrun, Ọlọrun kede ododo Rẹ, o si daabo bo ọwọ itẹ Rẹ. Ṣugbọn nigba ti eniyan ṣẹ nipa ṣiṣe igbọran si itanjẹ ẹmi iyapa, Ọlọrun fi ẹri ifẹ Rẹ han nipa fifi Ọmọ bibi Rẹ kan ṣoṣo silẹ lati ku fun iran ti o baku. Ninu iwẹnumọ ẹṣẹ, a fi iwa Ọlọrun han. Ọrọ nla lati ori agbelebu n fihan gbogbo agbaye wipe a ko le dẹbi iwa ẹṣẹ ti Lusifa yan ru iṣejọba Ọlọrun.

Ninu ijakadi laarin Kristi ati Satani, ni akoko iṣẹ iranṣẹ Kristi laye, a fi iwa atanniijẹ nla ni han. Ko si ohun ti o le mu ifẹ Satani kuro ni ọkan awọn angẹli ni ọrun ati gbogbo agbaye to ṣegbọran bii ogun buburu ti o gbe ko Olugbala araye. Ọrọ odi onigboya rẹ ti o sọ wipe ki Kristi o jọsin oun, igboya ikugbu rẹ ni gbigbe lọ si ori oke ati sonso tẹmpili, ero arankan ti o farahan ni riro Ọ ki O bẹ silẹ lati ori oke giga naa, arankan tí kò sùn, ti o n dọdẹ Rẹ lati ibi kan de ikeji, ti o ru ọkan awọn alufa ati awọn eniyan soke lati kọ ifẹ Rẹ silẹ, ati nikẹyin lati kigbe, "Kan An mọ agbelebu! Kan An mọ agbelebu!"—gbogbo iwọnyi ni o jẹ iyalẹnu fun gbogbo agbaye ti o si bi wọn ninu.

Satani ni o fa ki araye o kọ Kristi silẹ. Ọmọ alade iwa buburu lo gbogbo agbara ati alumọkọrọyi rẹ lati pa Jesu run nitori ti o ri wipe aanu ati ifẹ Olugbala, iyọnu ati iṣe jẹjẹ ikaanu Rẹ, n fi iwa Ọlọrun han araye. Satani jijadu fun gbogbo ọrọ ti Ọmọ Ọlọrun sọ, o si lo awọn eniyan gẹgẹ bi aṣoju rẹ lati mu ki igbesi aye Jesu o kun fun ijiya ati ibanujẹ. Ayinike ati ẹtan eyi ti o fẹ fi di iṣẹ Kristi lọwọ, ikorira ti awọn ọmọ alaigbọran fihan, ẹsun buburu ti o fi kan Ẹni ti igbesi aye Rẹ jẹ kiki da ohun rere ti a kò rírí, gbogbo wọn wá lati inu ifẹ jijinlẹ lati gbẹsan. Iná ilara ati arankan ti ko tete jade, ikorira ati igbẹsan, tu jade si Ọmọ Ọlọrun lori Kalfari, nigba ti gbogbo ọrun n wo iṣẹlẹ naa pẹlu ibẹru ati idakẹrọrọ.

Nigba ti irubọ nla naa pari, Kristi goke lọ si ọrun, ko gba ijọsin awọn angẹli titi ti O fi bẹbẹ wipe: “Emi fẹ ki awọn ti Iwọ fifun Mi wa pẹlu Mi, nibi ti Mo ba wa.” Johanu 17:24. Nigba naa pẹlu ifẹ ati agbara ti a ko le fẹnusọ ni idahun fi jade wa lati ori itẹ Baba: “Jẹ ki gbogbo awọn angẹli Ọlọrun jọsin fun.” Heberu 1:6. Ko si abawọn kankan lara Jesu. Iṣẹsilẹ Rẹ pari, irubọ Rẹ pari, a fun ni orukọ kan ti o ju gbogbo orukọ lọ.

Bayi ẹbi Satani duro gbọin laisi awawi. O ti fi iwa bi o ti jẹ han gẹgẹ bi onirọ ati apaniyan. A ri i wipe iru ẹmi kan naa ti o fi ṣe akoso awọn ọmọ eniyan, ti wọn wa labẹ agbara rẹ, ni i ba lo bi a ba gba a laaye lati ṣe akoso awọn olugbe ọrun. O ti sọ wipe riru ofin Ọlọrun yoo mu ominira ati igbega wa; ṣugbọn a ri wipe o yọri si igbekun ati iṣẹsilẹ.

Ẹsun irọ ti Satani fi kan iwa ati iṣejọba Ọlọrun farahan bi wọn ti ri gan an. O ti fi ẹsun kan Ọlọrun wipe O n wa ọna lati gbe ara Rẹ ga lasan ni nipa bibeere fun ijọsin ati igbọran lati ọdọ awọn ẹda Rẹ, o si wipe nigba ti Ẹlẹda n beere fun iṣẹra-ẹni lati ọdọ gbogbo awọn yoku, Oun funra Rẹ ko wuwa iṣẹra-ẹni bẹẹ ni ko fi ohunkohun silẹ. Ni bayii ti a ti ri wipe Alaṣẹ gbogbo agbaye ti ṣe irubọ ti o ga julọ ti ifẹ le ṣe fun igbala iran ti o baku; nitori “Ọlọrun wa ninu Kristi, O n ba araye laja pẹlu ara Rẹ.” 2 Kọrintin 5:19. A tun ri pẹlu wipe nigba ti Lusifa ṣilẹkun fun atiwọle ẹṣẹ nipasẹ ifẹ rẹ fun ọla ati iṣakoso, Kristi rẹ ara Rẹ silẹ lati le pa ẹṣẹ run, O si ṣe igbọran de oju iku.

Ọlọrun fi ikorira Rẹ han si iwa iṣọtẹ. Gbogbo ọrun ri wipe a fi ododo Rẹ han ni dida Satani lẹbi ati ni rira eniyan pada. Lusifa ti sọ wipe bi a ko ba le yi ofin Ọlọrun pada, a ko ni le mu ijiya rẹ kuro pẹlu, gbogbo arufin ni a gbọdọ di lọna lati ri oju rere Ẹlẹda titi lae. O ti sọ wipe iran ti o ṣẹ ti kọja eyi ti a le rapada, nitori naa wọn jẹ ẹran ijẹ ti ọ tọ si oun. Ṣugbọn iku Kristi jẹ itilẹyin fun eniyan, eyi ti a ko le bi lulẹ. Ijiya ofin ṣubu le Ẹni ti O ba Ọlọrun dọgba lori, eniyan si ni ominira lati gba ododo Kristi ati, pẹlu igbe aye ironupiwada ati

irẹsilẹ lati ṣẹgun, bi Ọmọ Ọlọrun ti ṣẹgun, lori agbara Satani. Bayi ni Ọlọrun ṣe jẹ olododo ti O tun jẹ Ẹni ti o da gbogbo ẹni ti o gbagbọ ninu Jesu lare.

Ṣugbọn ki i ṣe nitori irapada eniyan nikan ni Kristi ṣe wa si aye lati jiya ati lati ku. O wa lati "gbe ofin ga" ati lati "bu iyin fun." Ki i ṣe ki awọn olugbe aye yii le ri ofin gẹgẹ bi o ti yẹ ki wọn ri nikan; ṣugbọn lati fihan awọn aye yoku ni gbogbo agbala aye wipe ofin Ọlọrun ko le yipada. Bi o ba ṣe wipe a le kọ ọrọ Rẹ silẹ ni, ki ba ti nilo ki Ọmọ Ọlọrun O fi ẹmi Rẹ lelẹ lati ṣe etutu fun titẹ ẹ loju. Iku Kristi fihan wipe o duro titi lae. Ati irubọ ti ifẹ mu ki Baba ati Ọmọ o ṣe, ki a baa le ra ẹlẹṣẹ pada, fihan gbogbo agbaye—ohun ti eto iwẹnumọ nikanṣoṣo tó lati ṣe—wipe ododo ati aanu ni ipilẹ ofin ati iṣejọba Ọlọrun.

Ninu idajọ ikẹyin a o ri wipe ko si idi ti o fi yẹ ki ẹṣẹ o wa. Nigba ti Onidajọ gbogbo aye a bere lọwọ Satani, "Kilode ti o fi ṣọtẹ si Mi, ti o si jí awọn ọmọ ijọba Mi?" Ipilẹṣẹ ibi ko ni ri awawi kan ṣe. Gbogbo ẹnu ni yoo dakẹ, ti gbogbo ogun iṣọtẹ a si wa ni airiwi.

Agbelebu Kalfari, nigba ti o n sọ wipe ofin Ọlọrun wa titi lae, o kede fun gbogbo agbaye wipe iku ni ere ẹṣẹ. Ninu igbe ikẹyin Olugbala, "O pari," a lu agogo iku Satani. Nigba naa ni a ṣe ipinu lori ijakadi nla ti o ti wa fun ọjọ pipẹ, ti o si daniloju wipe a o pa iwa buburu run nikẹyin. Ọmọ Ọlọrun la inu iboji kọja, ki "O le tipasẹ iku pa ẹni ti o ni agbara iku run, eyi ti i ṣe eṣu." Heberu 2:14. Ifẹ Lusifa fun igbega ni o jẹ ki o sọ wipe: "Emi yoo gbe itẹ mi ga ju irawọ Ọlọrun lọ: . . . Emi yoo dabi Ẹni Giga julọ." Ọlọrun sọ wipe: "Emi yoo sọ ọ di eeru lori ilẹ aye, . . . iwọ ki yoo si sí mọ titi lae." Aisaya 14:13, 14; Isikiẹli 28:18, 19. Nigba ti "ọjọ naa ba de, ti yoo jo bi ina ileru; . . . gbogbo agberaga, bẹẹni ati gbogbo awọn ti wọn wuwa ibi, yoo dabi ageku koriko: ọjọ naa n bọ wa ti yoo jo wọn run, ni Oluwa awọn ọmọ ogun wi, ti ki yoo si fi gbongbo tabi ẹka wọn silẹ." Malaki 4:1

Gbogbo agbala aye ni yoo ṣe ẹlẹri si iwa ati ayọrisi ẹṣẹ. Iparun rẹ patapata, eyi ti i ba ba awọn angẹli lẹru, ti ko si ni bu ọla fun Ọlọrun ni ibẹrẹ, yoo wa da ifẹ Rẹ lare yoo si fi idi ọla Rẹ mulẹ laarin gbogbo awọn ti wọn fẹ lati ṣe ifẹ Rẹ, ati awọn ti ofin Rẹ wa ninu ọkan wọn. Iwa buburu ki yoo si farahan mọ. Ọrọ Ọlọrun sọ wipe: "Ijiya ki yoo dide lẹẹkeji." Nahumi 1:9. Ofin Ọlọrun ti Satani kẹgan gẹgẹ bi ajaga inira ni a o bọwọ fun bi ofin ominira. Ẹda ti a ti danwo ti o si ti yege ko tun ni yipada kuro ninu igbọran si Ẹni ti a fi iwa Rẹ han ni kikun niwaju wọn gẹgẹ bi ifẹ ti a ko ri idi rẹ ati ọgbọn ailopin.

30

Ikorira Laarin Eniyan Ati Satani

"Emi yoo si fi ọta si aarin iwọ ati obinrin naa, ati si aarin iru ọmọ rẹ ati iru ọmọ rẹ; yoo pa ọ ni ori, iwa yoo si pa ni gigisẹ." Jẹnẹsisi 3:15. Idajọ ti Ọlọrun ṣe fun Satani lẹyin iṣubu eniyan jẹ asọtẹlẹ pẹlu, ti o yi gbogbo akoko po titi de opin akoko ti o si ṣe awojiji fun ijakadi nla ti yoo kan gbogbo ẹni ti yoo gbe ni ori ilẹ aye.

Ọlọrun sọ pe: "Emi yoo fi ọta." Iṣọta yii ki i ṣe eyi ti a dani mọ. Nigba ti eniyan ṣẹ si ofin Ọlọrun, iṣẹda rẹ da ibi, o wa ni iṣọkan, ki i ṣe iṣọta, pẹlu Satani. Ko si iṣọta kankan laarin ẹlẹṣẹ ati olupilẹṣẹ ẹṣẹ. Awọn mejeeji ni wọn ti di ẹni buburu nipasẹ iyapa. Ẹni iyapa nì ko ni sinmi ayafi igba ti o ba ri ikaanu ati iranlọwọ nipa mimu ki awọn eniyan o tẹle apẹẹrẹ rẹ. Fun idi eyi awọn angẹli ti wọn ṣubu ati awọn eniyan buburu wa ni iṣọkan pẹlu ibaṣepọ ti o lagbara. Bi ki i ba n ṣe wipe Ọlọrun da a duro ni ọna pataki ni, Satani ati eniyan i ba wa ni iṣọkan lati tako Ọrun; dipo ki a fẹ lati korira Satani, gbogbo idile eniyan i ba wa ni iṣọkan lati tako Ọlọrun.

Satani tan eniyan jẹ lati dẹṣẹ, gẹgẹ bi o ti mu ki awọn angẹli o ṣọtẹ, ki o baa le ri ifọwọsowọpọ wọn ninu ijakadi rẹ pẹlu ọrun. Ko si ede aiyede laarin oun ati awọn angẹli ti wọn ṣubu nipa ikorira wọn fun Kristi; bi o tilẹ jẹ wipe lori gbogbo awọn ohun yoku ede wọn ko yera, wọn fọwọsowọpọ gidigidi ni titako aṣẹ alakoso gbogbo aye. Ṣugbọn nigba ti Satani gbọ ti a kede wipe iṣọta yoo wa laarin oun ati obinrin naa, laarin iru ọmọ rẹ ati iru ọmọ rẹ, o mọ wipe a ti da akitiyan oun lati ba irisi eniyan jẹ duro; nipasẹ ọna kan, a yoo fun eniyan lokun lati doju ija kọ agbara oun.

Ikorira Satani ru si iran eniyan nitori pe, nipasẹ Kristi, wọn jẹ afojusun ifẹ ati aanu Ọlọrun. O fẹ lati ba eto Ọlọrun fun irapada eniyan

jẹ, lati ko abuku ba Ọlọrun, nipa biba iṣẹ ọwọ Rẹ loju jẹ ati sisọ ọ di aimọ; yoo fa ibanujẹ ni ọrun yoo si fi wahala ati iparun kun inu aye. A wa nawọ si gbogbo iwa buburu wọnyi gẹgẹ bi ayọrisi iṣẹ Ọlọrun ni dida eniyan.

Oore ọfẹ ti Kristi fi sinu ọkan ni o fa iṣọta si Satani ninu ọkan eniyan. Laisi oore ọfẹ ti n yini pada ati agbara atunnkanṣe yii, eniyan a tẹsiwaju lati jẹ igbekun Satani, iranṣẹ ti yoo ṣetan ni gbogbo igba lati tẹle aṣẹ rẹ. Ṣugbọn ilana tuntun ninu ọkan da ija silẹ nibi ti alaafia ti wa tẹlẹ. Agbara ti Kristi n fifunni ran eniyan lọwọ lati koju ija si onroro ati ẹni ti o fi ipa gba ohun ti ko to si naa. Ẹnikẹni ti a ba ri ti o ba korira ẹṣẹ dipo ki o fẹran rẹ, ẹnikẹni ti o ba doju ija kọ ifẹ ọkan ti n jọba ninu ti o si ṣẹgun rẹ ṣe afihan agbara ti o ti oke wa.

Ikorira ti o wa laarin ẹmi Kristi ati ẹmi Satani ni a fihan ni pataki julọ ninu bi araye ṣe tẹwọgba Jesu. Ki i ṣe nitori pe ko ni ọrọ aye, iwuga tabi ẹwa ni iri ni o jẹ ki awọn Ju o kọ Ọ. Wọn ri wipe O ni agbara ti o niyelori ju awọn aini ti ode ara wọnyi lọ. Ṣugbọn iwa ailabawọn ati iwa mimọ Kristi ni o fa ikorira ti awọn alaiwabiọlọrun fun. Igbesi aye iṣẹra-ẹni Rẹ ati ifọkansin alailẹṣẹ Rẹ jẹ ibawi atigbadegba fun awọn eniyan agberaga ati onifẹkufẹ ara. Eyi ni o fa iṣọta si Ọmọ Ọlọrun. Satani ati awọn angẹli buburu sowọpọ mọ awọn eniyan buburu. Gbogbo agbara ẹmi iyapa ni wọn ṣọtẹ papọ si Aṣẹgun fun otitọ.

Iru iṣọta kan naa ni a fihan si awọn atẹle Kristi gẹgẹ bi a ti fihan si Ọga wọn. Ẹnikẹni ti o ba ri bi ẹṣẹ ti jẹ irira to, ti o si doju ija kọ idanwo pẹlu agbara lati oke wa, yoo ru ibinu Satani ati ti awọn atẹle rẹ soke ni dandan. Ikorira ẹkọ otitọ ti ko labawọn, ati ifiṣẹsin ati inunibini si awọn ti n waasu rẹ, yoo wa niwọn igba ti ẹṣẹ ati awọn ẹlẹṣẹ ba wa. Awọn atẹle Kristi ati iranṣẹ Satani ko le wa ni irẹpọ. Ohun idigbolu ninu agbelebu koi tii kuro. “Gbogbo ẹni ti yoo gbe ni iwabiọlọrun ninu Kristi Jesu yoo jiya inunibini.” 2 Timoti 3:12.

Awọn aṣoju Satani n ṣiṣẹ loorekoore labẹ akoso rẹ lati fi idi aṣẹ rẹ mulẹ ati lati kọ ijọba rẹ ni atako si ijọba Ọlọrun. Nitori eyi wọn wa ọna lati tan awọn atẹle Kristi jẹ ati lati fa wọn kuro ninu igbọran wọn. Bi i ti olori wọn, wọn n ṣe afihan Iwe Mimọ ni ọna ti ko to, wọn si n lọ lọrun lati ṣe iṣẹ wọn. Bi Satani ti n ṣe akitiyan lati ko ẹgan ba Ọlọrun, bẹẹ gẹgẹ ni awọn aṣoju rẹ n ṣiṣẹ lati ṣaata awọn eniyan Ọlọrun. Ẹmi ti o ṣe iku pa Kristi n mi si awọn ẹni buburu lati pa awọn atẹle Rẹ run. Gbogbo eyi ni a sọtẹlẹ ninu asọtẹlẹ akọkọ: “Emi yoo fi ọta si aarin iwọ ati obinrin naa, ati si aarin iru ọmọ rẹ ati iru ọmọ rẹ.” Eyi yoo tẹsiwaju titi di opin akoko.

Satani ko gbogbo ipa rẹ jọ, o si ju gbogbo agbara rẹ sinu ija naa. Kilo de ti ko ri atako ti o ga? Kilo de ti awọn ọmọ ogun Kristi fi n sun

ti wọn ko si bikita? Nitori ti wọn ko ni ibaṣepọ ti o lagbara pẹlu Kristi ni; nitori ti wọn ko ni Ẹmi Rẹ ni. Ẹṣẹ ko jẹ irira si wọn, ko si kà wọn laya, gẹgẹ bi o ti ṣe si Oluwa wọn. Wọn ko doju kọ ọ bi Kristi ti ṣe, pẹlu igbejako ti o lagbara ti o si ni ipinu. Wọn ko ri bi ẹṣẹ ti buru jọjọ ti o si ṣe ni iwa ika to, wọn fọju si iwa ati agbara ọmọ alade okunkun. Iṣọta kekere ni o wa fun Satani ati iṣẹ rẹ, nitori aimọkan nla ni o wa nipa agbara ati arankan rẹ, ati bi ijakadi rẹ pẹlu Kristi ati ijọ Rẹ ti pọ to. Nibi ni a ti tan ọpọlọpọ jẹ. Wọn ko mọ wipe ọgagun alagbara ti o n dari ọkan awọn angẹli buburu ni ọta wọn, ẹni ti o n ba Kristi jagun lati maṣe jẹ ki a gba ọkan la pẹlu eto ti o gbe kalẹ rẹgi, ati iṣọwọṣiṣẹ pẹlu ọgbọn. Laarin awọn ti wọn pe ara wọn ni Kristeni, ani laarin awọn oniwaasu iyinrere, a ki i saba n sọ nipa Satani, ayafi bi a ba kan mẹnu ba a lerefe lori pẹpẹ iwaasu. Wọn fi oju fo awọn ẹri fun iṣẹ rẹ nigba gbogbo ati aṣeyọri rẹ da; wọn ko naani ọpọlọpọ ikilọ nipa arekereke rẹ; o dabi ẹnipe wọn jẹ alaimọkan nipa iwalaaye rẹ.

Nigba ti awọn eniyan jẹ alaimọkan nipa ete rẹ, ọta ti n ṣọra yii n ṣọ gbogbo irinsi wọn. Gbogbo abala ile ni o n fi ipa wọ, ninu gbogbo adugbo wa, ninu awọn ijọ, ninu awọn igbimọ orilẹ ede, ninu gbọngan idajọ, o n ko iporuuru ọkan bani, o n tannijẹ, o n danni wo, ni ibi gbogbo o n ba ọkan ati ara ọkunrin ati obinrin ati ọmọde jẹ, o n fọ idile ka, o n gbin ikorira, ijowu, ija, iyapa, ati ipaniyan kalẹ. O dabi ẹnipe awọn Kristẹni ri awọn nnkan wọnyi bi ẹnipe Ọlọrun ti ṣe wọn bẹẹ ati pe wọn gbọdọ wa.

Satani n ṣiṣẹ ni gbogbo igba lati bori awọn eniyan Ọlọrun nipa bibi ohun ti o pin wọn niya pẹlu aye lulẹ. A ti awọn ọmọ Israeli atijọ sinu ẹṣẹ nigba ti wọn ba wọ inu ibaṣepọ ti ko tọ pẹlu awọn alaigbagbọ. “Ọlọrun aye yii ti fọ awọn ti ko gbagbọ niye, ki imọlẹ ologo ti iyinrere Kristi, Ẹni ti i ṣe aworan Ọlọrun, ma baa tan si wọn.” 2 Korintin 4:4. Iranṣẹ Satani ni gbogbo awọn ti ko ba pinnu lati tẹle Kristi jẹ. Ifẹ ẹṣẹ ati ẹmi lati fẹ ati lati ṣe awawi saba maa n wa ninu ọkan ti koi tii yipada. Ikorira ẹṣẹ, ati ipinu lati koju ija si saba maa n wa ninu ọkan ti a sọ dọtun. Nigba ti Kristẹni ba yan awujọ awọn alaiwabiọlọrun ati awọn alaigbagbọ, wọn fi ara wọn silẹ fun idanwo. Satani fi ara rẹ pamọ, a si maa fi ẹtan rẹ bo wọn loju diẹdiẹ. Wọn ko le ri wipe awujo naa wa lati ṣe wọn nijamba; nigba ti wọn ba si n dabi aye ni iwa, ọrọ ati iṣe ni gbogbo igba bẹẹ ni oju wọn a maa fọ si.

Ibadọgba pẹlu aṣa aye maa n yi ọkan ijọ pada sinu aye ni; ki i maa n yi aye pada sinu Kristi. Ni dandan, ibarẹ pẹlu ẹṣẹ koni jẹ ki o kanilaya mọ. Ẹnikẹni ti o ba yan lati ba awọn iranṣẹ Satani ni ajọṣepọ ko ni bẹru ọga wọn mọ laipẹ. Bi a ba bọ sinu idanwo lẹnu ojuṣe wa, bi

i Danięli ninu aafin ọba, o yę ki o da wa loju wipe Ọlọrun a daabo bo wa; ṣugbọn bi a ba fi ara wa si abę idanwo, boopę booya, a yoo ṣubu.

Adanniwo maa n ṣiṣę pęlu aṣeyọri nipasę awọn ti wọn ko lero pe wọn wa labę iṣakoso rę. A maa n yin awọn ti wọn ni ębun ti wọn tun kawe a si tun n bọla fun wọn, a fi bi ęnipe awọn ębun wọnyi le rọpo ainibęru Ọlọrun wọn tabi ki wọn mu eniyan ri oju rere Ọlọrun. Ębun ati ọlaju funra wọn ję ębun Ọlọrun; ṣugbọn nigba ti a ba fę ki awọn wọnyi rọpo iwabiọlọrun, nigba ti wọn ba n dari wa kuro ni ọdọ Ọlọrun dipo ki wọn mu wa sunmọ si, wọn ti di egun ati ębiti ikọsę. O ję igbagbọ ti o wọpọ wipe ohun gbogbo ti o ba fara han bi inu rere ati iwa ti o bojumu, ni ọna kan tabi omiran nilati ję ti Kristi. Ko si aṣiṣe ti o tobi ju eyi lọ. Awọn iwa wọnyi nilati sọ gbogbo iwa Kristęni lójò, nitori ti wọn ni ipa ti o lagbara lati le mu ki a fi oju rere wo ęsin tootọ; ṣugbọn a nilati ya wọn si mimọ fun Ọlọrun, laiṣe bęę, wọn le ję agbara fun ibi. Ọpọlọpọ awọn ti wọn ję ọlaju ti wọn n wuwa ti o yę, ti wọn ko ni rę ara wọn silę debi ti wọn yoo fi wuwa ti a ka si iwa aitọ, ni wọn ję ohun elo ni ọwọ Satani. Iwa itanniję ati ęlętan wọn ati apęęrę wọn mu ki wọn ję ọta ti o lewu fun iṣę Kristi ju awọn ti ko laju ti wọn si ję alaimọkan lọ.

Pęlu adura atọkanwa ati igbarale Ọlọrun, Solomoni ni ọgbọn eyi ti o ję iyalęnu ati ijọloju fun aye. Ṣugbọn nigba ti o yipada kuro ni ọdọ Ipilę okun rę, ti o tęsiwaju lati gbękęle ara rę, o ṣubu bi ęran ije fun idanwo. Agbara agbayanu ti a fun ọba ti o gbọn julọ naa wa sọ ọ di ọta ọkan ti o lagbara.

Nigba ti Satani n ṣiṣę ni gbogbo igba lati maṣe ję ki wọn ri eyi, awọn Kristęni ko gbọdọ gbagbe wipe, “ki i ṣe ęję tabi ęran ara ni a n ba jijakadi ṣugbọn awọn ijọba oju ọrun, awọn alagbara, awọn alaṣę ibi okunkun aye yii, ati awọn ęmi buburu ni oju ọrun.” Efesu 6:12. Ikilọ imisi lati atęyinwa titi di akoko wa yii ni: “Ę maa wa ni airekọja, ę maa ṣọra; nitori eṣu ọta yin, bi kiniun ti n ke ramuramu, n rin kaakiri, o n wa ęni ti yoo paję.” 2 Peteru 5:8. “Ę gbe gbogbo ihamọra Ọlọrun wọ, ki ęyin le duro doju kọ awọn arekereke eṣu.” Efesu 6:11.

Lati igba Adamu titi di akoko wa yii, ọta nla wa ti n lo agbara rę lati jęni niya ati lati panirun. Bayi o n mura silę fun ijakadi ikęyin rę pęlu ijọ. Gbogbo ęni ti o ba n fę lati tęle Jesu yoo doju ija kọ ọta ti ki i dęyin yii. Bi Kristęni ba ti n tęle Apęęrę ọrun to, bęę ni o n fi ara rę han sita to fun atako Satani. Gbogbo awọn ti wọn n mura si iṣe Ọlọrun, ti wọn n wa lati yọ oju irọ ęni ibi ni sita ti wọn si fę fi Kristi han awọn eniyan yoo fi ohun ṣọkan pęlu ęri Pọlu, nibi ti o ti sọ nipa sisin Ọlọrun pęlu iręlę ọkan, pęlu ọpọlọpọ omije ati idanwo.

Satani doju kọ Kristi pęlu idanwo rę ti o le, ti o tun ṣe arekereke julọ. A ja awọn ogun wọnyi nitori wa; awọn iṣęgun wọnni ni wọn ję

ki o ṣe e ṣe fun wa lati ṣẹgun. Kristi yoo fi okun Rẹ fun gbogbo ẹni ti o ba wa. Ko si ẹni ti Satani le bori laiṣe wipe o ba fi ọwọ si. Oludanwo ko ni agbara lati dari ọkan eniyan tabi lati fi ipa muni lati dẹṣẹ. O le danilaamu, ṣugbọn ko le banijẹ. O le fa ibanujẹ, ṣugbọn ko le sọni di eeri. Nitori pe Kristi ti ṣẹgun, o yẹ ki eyi o fun awọn atẹle Rẹ ni igboya lati ja bi ọkunrin ninu ogun pẹlu ẹṣẹ ati Satani.

31

Aṣoju Awọn Ẹmi Eṣu

Ibaṣepọ ti o wa laarin aye ti a ri ati aye airi, iṣẹ iranṣẹ awọn angẹli Ọlọrun ati aṣoju awọn ẹmi eṣu ni a fihan kedere ninu Iwe Mimọ, a ko sile yọ wọn kuro ninu itan iran eniyan. O wọpọ ni ode oni lati maṣe gbagbọ wipe awọn ẹmi eṣu wa, nigba ti a ri awọn angẹli mimọ ti wọn n "ṣiṣẹ iranṣẹ fun awọn ti yoo jogun igbala" (Heberu 1:14) bi ẹmi awọn oku. Ṣugbọn ki i ṣe wipe Iwe Mimọ kọ wa wipe awọn angẹli wa nikan, ati rere ati buburu, ṣugbọn o fiyeni laiṣe iyemeji wipe wọn ki i ṣe ẹmi awọn oku.

Ṣaaju ki a to da eniyan, awọn angẹli ti wa; nitori nigba ti a ṣe ipilẹ aye, "awọn irawọ owurọ kọrin, gbogbo awọn ọmọ Ọlọrun si kigbe fun ayọ." Jobu 38:7. Lẹyin iṣubu eniyan, a ran awọn angẹli lati ṣọ igi iye, eyi si ṣẹlẹ ki eniyan kankan o to ku. Nipa iṣẹda wọn, awọn angẹli lagbara ju eniyan lọ, nitori ti Onisaamu sọ wipe a da eniyan "rẹlẹ ju awọn angẹli lọ." O. Dafidi 8:5.

A sọ iye wọn fun wa ninu Iwe Mimọ ati agbara ati ogo awọn ẹda ọrun, ibaṣepọ wọn pẹlu iṣejọba Ọlọrun ati ibaṣepọ wọn pẹlu iṣẹ irapada. "Oluwa ti pese itẹ Rẹ silẹ ni awọn ọrun, ijọba Rẹ si n jọba lori ohun gbogbo." Woli naa sọ wipe, "Mo gbọ ohun ọpọ awọn angẹli yi itẹ naa ka." Ninu aafin Ọba awọn ọba wọn duro—"awọn angẹli ti wọn pọ ni ipa," "awọn iranṣẹ Rẹ ti wọn n ṣe didun inu Rẹ," "ti wọn n gbọ ohùn ọrọ Rẹ." O. Dafidi 103:19—21; Ifihan 5:11. Ẹgbaarun lọna ẹgbaarun ati ẹgbẹrun lọna ẹgbẹrun ni awọn iranṣẹ ọrun ti woli Daniẹli ri. Apostoli Pọlu sọ wipe wọn jẹ "ọ̀wọ́ ti a ko le kà." Daniẹli 7:10; Heberu 12:22. Gẹgẹ bi iranṣẹ Ọlọrun, wọn jade lọ, bi "kikọ mọnamọna," Isikiẹli 1:14, ogo wọn tan pupọpupọ, bẹẹ si ni

wọn fò yara kankan. Angẹli ti o farahan nibi iboji Olugbala, ti irisi rẹ “dabi mọnamọna, aṣọ rẹ dabi yinyin,” mu ki awọn oluṣọ o wariri nitori ibẹru rẹ, wọn “si dabi oku.” Matiu 28:3, 4. Nigba ti Senakerubu, agberaga ara Asiria, kẹgan ti o si sọ ọrọ odi si orukọ Ọlọrun, ti o fi iparun ṣẹruba Israeli, “o ṣẹlẹ wipe ni aṣalẹ naa, angẹli Oluwa jade lọ, o si pa ọkẹ mẹsan o le ẹgbẹẹdọgbọn eniyan ni ibudo awọn ara Asiria.” A “ge gbogbo awọn alagbara ogun, ati awọn aṣaaju, ati awọn balogun,” kuro ninu awọn ọmọ ogun Senakerubu. “O si pada si ile rẹ pẹlu itiju.” 2 Awọn Ọba 19:35; 2 Kronika 32:21.

A n ran awọn angẹli ni iṣẹ aanu si awọn ọmọ Ọlọrun. Si Abrahamu pẹlu ileri ibukun; si awọn ilẹkun Sodomu, lati gba Lọti olododo silẹ kuro ninu iparun ina; si Elija bi aarẹ ati ebi ti fẹ gba ẹmi rẹ ninu aṣalẹ; si Elisha pẹlu kẹkẹ ina ati ẹṣin ina ti wọn yi ilu kekere naa ka nibi ti awọn ọta ti i mọ; si Danieli, nigba ti o n wa ọgbọn Ọlọrun ninu aafin ọba abọriṣa, tabi nigba ti a fi silẹ lati di ẹran ijẹ kiniun; si Peteru ti a ti dajọ iku fun ninu ọgba ẹwọn Hẹrọdu; si awọn ẹlẹwọn ni Filipi; si Pọlu ati awọn akẹgbẹ rẹ ninu ẹfufu lile oru lori okun; lati ṣi iye Kọneliu lati gba iyinrere, lati ran Peteru pẹlu iṣẹ iranṣẹ igbala si ajeji Keferi—ni igba gbogbo ni a ri ti awọn angẹli n ṣiṣẹ fun awọn eniyan Ọlọrun.

A ti yan awọn angẹli oluṣọ kọọkan fun gbogbo atẹle Kristi. Awọn oluṣọ ọrun wọnyi ni wọn n daabo bo awọn olododo kuro lọwọ agbara eṣu. Eyi ni Satani funra rẹ tọka si nigba ti o sọ pe: “Jobu ha bẹru Ọlọrun lasan bi? Iwọ ko ha ṣọgba yi ka, ati ile rẹ, ati gbogbo ohun ti o ni ni iha gbogbo?” Jobu 1: 9, 10. Awọn ọna ti Ọlọrun n gba lati daabo bo awọn eniyan Rẹ ni a fihan ninu awọn ọrọ Onisaamu “Angẹli Oluwa yi awọn ti o bẹru Rẹ ka, o si gba wọn.” O. Dafidi 34:7. Nigba ti O n sọ nipa awọn ti wọn gbagbọ ninu Rẹ, Olugbala sọ wipe: “Ẹ kiyesara ki ẹ maṣe gan ọkan ninu awọn kekeeke wọnyi; nitori mo sọ fun yin, wipe ni ọrun, ni igba gbogbo ni awọn angẹli wọn n wo oju Baba Mi.” Matiu 18:10. Awọn angẹli ti a yan lati ṣe iṣẹ iranṣẹ fun awọn ọmọ Ọlọrun maa n ri aye de ọdọ Rẹ ni igba gbogbo.

Awọn eniyan Ọlọrun ti wọn n ri agbara ẹtan ati arankan ti ko dẹyin ọmọ alade okunkun, ati ijakadi pẹlu gbogbo agbara buburu, ni idaniloju iṣọ awọn angẹli ọrun. A ko funni ni iru idaniloju yii laisi idi fun. Bi Ọlọrun ba fun awọn ọmọ Rẹ ni ileri oore ọfẹ ati aabo, nitori pe wọn yoo koju awọn aṣoju iwa ibi ti wọn lagbara ni—awọn aṣoju ti wọn pọ, ti wọn lagidi, ti ki i kaarẹ, ti ko si ẹni ti o le wa ni aimọkan tabi aibikita si agbara ati arankan wọn ki o si wa ni ailewu.

Ni atetekọṣe, a da awọn ẹmi buburu wọnyi ni ailẹṣẹ, wọn dọgba ni iṣẹda, agbara ati ogo pẹlu awọn ẹda mimọ ti wọn jẹ iranṣẹ Ọlọrun bayii. Ṣugbọn wọn ṣubu nipasẹ ẹṣẹ, wọn wa fọwọsowọpọ fun abuku

Ọlọrun ati iparun eniyan. Ni iṣọkan pẹlu Satani ninu iṣọtẹ rẹ, a le wọn kuro ni ọrun papọ pẹlu rẹ, wọn si fọwọsowọpọ pẹlu rẹ ninu ijakadi rẹ pẹlu aṣẹ Ọlọrun ni igba gbogbo. A sọ fun wa ninu Iwe Mimọ nipa irẹpọ ati iṣejọba wọn, orişirişi abala ti wọn pin si, ọgbọn ati arekereke wọn, ati ete buburu wọn lati tako alaafia ati idunnu eniyan.

Itan inu Iwe Majẹmu Laelae sọ fun wa iwalaaye wọn ati iṣọwọṣişẹ wọn lerefe; ṣugbọn ni akoko ti Kristi wa lori ilẹ aye ni awọn ẹmi eṣu fi agbara wọn han ni ọna ti o lagbara julọ. Kristi ti bẹrẹ iṣẹ lori eto ti a ṣe fun irapada eniyan, Satani si pinu lati lo ẹtọ rẹ lati dari aye. O ti ṣe aṣeyọri ni fifi ẹsin ibọrişa lelẹ ni gbogbo aye ayafi ni ilẹ Palestine. Ilẹ kan ṣoṣo ti koi ti i bọ sọwọ adanniwo patapata. Kristi wa lati tan imọlẹ ọrun sori awọn eniyan. Nibi awọn agbara meji n jijadu fun akoso. Jesu n na ọwọ ifẹ Rẹ O n pe gbogbo awọn ti wọn ba fẹ lati gba idariji ẹṣẹ ati alaafia ninu Oun. Awọn ẹgbẹgun okunkun ri wipe wọn ko ni agbara ayeraye, wọn si ni oye wipe bi iṣẹ Kristi ba yọri si rere, iṣakoso wọn yoo pari laipẹ. Satani binu bi kiniun ti a fi ẹwọn si lọrun o si fi agidi lo agbara rẹ lori ara ati ọkan eniyan.

A sọ ọ kedere ninu Iwe Majẹmu Tuntun wipe awọn eniyan n ni ẹmi aimọ. Awọn ti a ba fiyajẹ bayii ki i jiya aisan ara lasan. Kristi ni oye pipe nipa ohun ti Oun n ṣiṣẹ pẹlu, O si mọ wipe awọn ẹmi eṣu yii wa.

Apẹẹrẹ ti o han kedere nipa iye, agbara ati iwa buburu wọn, ati agbara ati aanu Kristi pẹlu ni a ri ninu alaye Iwe Mimọ nipa wiwo ẹlẹmi aimọ ti Gadara san. Awọn were otoṣi yii kọ gbogbo ikoraẹni-nijanu silẹ, wọn n gbolẹ, wọn n ru itọ lẹnu, wọn n binu, ayika si kun fun ariwo wọn, wọn n ṣe ara wọn nijamba, wọn si n ṣe gbogbo ẹni ti o ba sunmọ wọn nijamba pẹlu. Ara wọn ti n ṣẹjẹ ti o ti bajẹ ati iye wọn ti o ti síwín jẹ ohun ti o dun mọ ọmọ alade okunkun ninu. Ọkan ninu awọn ẹmi aimọ ti n dari awọn ti n jiya yii sọ wipe: “Orukọ mi ni Lijioni: nitori ti a pọ.” Maku 5:9. Ninu ẹgbẹ ogun Romu, lijioni to bi ẹgbẹrun mẹta si marun ọmọ ogun. Awọn ọmọ ogun Satani pẹlu wa lẹgbẹẹgbẹ, ẹgbẹ kan ṣoṣo ti awọn ẹmi aimọ wa ko kere ju lijioni kan lọ.

Ni aṣẹ Jesu awọn ẹmi aimọ naa fi ẹni ti wọn n fiyajẹ silẹ, ara wọn balẹ, wọn joko labẹ ẹsẹ Olugbala, oju wọn walẹ, wọn ni oye, wọn si ni irẹlẹ. Ṣugbọn a gba awọn ẹmi aimọ naa laaye lati gba agbo ẹlẹdẹ kan sinu okun; adanu yii pọ loju awọn ara Gadara ju ibukun ti Kristi fifunni lọ, a si rọ Oluwosan ọrun lati kuro nibẹ. Eyi jẹ atubọtan ti Satani fẹ lati ri. Nipa kiko ẹbi adanu wọn si ori Jesu, o ru ẹru onimọ-ti-ara-ẹni-nikan awọn eniyan naa soke, o si di wọn lọwọ lati gbọ ọrọ Rẹ. Ni igba gbogbo ni Satani n fi ẹsun kan awọn Kristẹni gẹgẹ bi okunfa adanu, ajalu ati ijiya dipo ki o jẹ ki ẹgan naa bọ si ibi ti o yẹ—ori ara rẹ ati awọn aṣoju rẹ.

Ṣugbọn eto Kristi ko yipada. O gba awọn ẹmi eṣu laaye lati pa agbo ẹlẹdẹ naa run gẹgẹ bi ibawi fun awọn Ju ti wọn n sin ẹran aimọ yii nitori owo. Ti ki i ba n ṣe wipe Kristi da awọn ẹmi aimọ naa lẹkun ni, ki i ṣe awọn ẹlẹdẹ nikan ni wọn i ba ti sinu okun, ṣugbọn ati awọn oluṣọ wọn ati awọn to ni wọn pẹlu. Agbara Rẹ nikan ṣoṣo ni o fi pa awọn oluṣọ ati awọn ti wọn ni ẹlẹdẹ naa mọ, ninu aanu O lo o fun igbala wọn. Siwaju si, a gba iṣẹlẹ yii laaye lati ṣẹlẹ ki awọn ọmọ ẹyin le jẹri si agbara buburu ti Satani ni lori eniyan ati ẹranko. Olugbala fẹ ki awọn atẹle Rẹ o ni imọ nipa ọta ti wọn yoo koju, ki a maa baa tan wọn jẹ ki a si bori wọn nipasẹ arekereke rẹ. O tun jẹ ifẹ Rẹ pẹlu ki awọn eniyan agbegbe naa o ri agbara Rẹ lati ja igbekun Satani ati lati tu onde silẹ. Bi o tilẹ jẹ wipe Jesu funra Rẹ fi ibẹ silẹ, awọn eniyan ti a fi iyanu tu silẹ duro nibẹ lati kede aanu Ẹni ti o ṣe wọn loore.

Awọn apẹẹrẹ miran ti wọn fi ara jọ eyi ni a kọ sinu Iwe Mimọ. Ẹmi aimọ n damu ọdọmọbinrin ara Sirofenisia pupọpupọ, eyi ti Jesu le jade pẹlu ọrọ Rẹ. Maku 7:26—30. "Ọkan ti o ni ẹmi aimọ, ti o yadi ti ko si le sọrọ" (Matiu 12:22); ọdọ kan ti o ni ẹmi iyadi ti o saba maa "n sọ ọ sinu ina, ati sinu omi, lati pa a run." (Maku 9:17—27); wèrè ti, "ẹmi aimọ n da laamu" (Luku 4:33—36) tí o di idakẹrọrọ inu sinagọgu lọwọ ni ọjọ isinmi ni Kapanaumu—gbogbo wọn ni Olugbala alaanu wosan. Ni ibi gbogbo, Kristi sọrọ si awọn ẹmi aimọ bi ẹni ti o ni oye, ti O si paṣẹ fun wọn lati jade kuro ninu ẹni ti wọn n jẹ niya, ki wọn ma si ṣe damu rẹ mọ. Awọn olujọsin ni Kapanaumu, nigba ti wọn ri agbara nla Rẹ, "yanu, wọn si sọ laarin ara wọn wipe, Iru ọrọ wo ni eyi! nitori pẹlu aṣẹ ati agbara ni O fi paṣẹ fun awọn ẹmi aimọ, wọn si jade sita." Luku 4:36.

A saba maa n fi awọn ti wọn ni ẹmi aimọ han bi ẹnipe wọn n jiya pupọpupọ; ṣugbọn ki i ri bẹẹ ni gbogbo igba. Lati le ri agbara ẹmi, awọn miran gba agbara Satani laaye. Awọn wọnyi ki i ni wahala pupọ pẹlu awọn ẹmi aimọ. Lara ẹgbẹ yii ni awọn ti wọn ni ẹmi afọṣẹ wa,—Simoni Magu, Elima oṣo, ati ọmọbinrin ẹni ti o n tẹle Pọlu ati Sila ni Filipi.

Ko si ẹni ti o wa ninu ewu iṣakoso awọn ẹmi aimọ bi awọn ti wọn ko gbagbọ wipe eṣu ati awọn angẹli rẹ wa, pẹlu gbogbo ẹri ti o pọ yanturu ninu Iwe Mimọ. Niwọn igba ti a ba jẹ alaimọkan nipa arekereke wọn, wọn ni anfani ti o pọ; ọpọlọpọ ni wọn n tẹle àbá wọn, nigba ti wọn n ro wipe wọn n tẹle ọgbọn ara wọn. Idi niyi, bi a ti n sunmọ opin akoko, nigba ti Satani yoo ṣiṣẹ pẹlu agbara nla lati ṣe itanjẹ ati lati panirun, o n tan igbagbọ wipe oun ko si kaakiri. Iwa rẹ ni lati fi ara rẹ ati iṣọwọṣiṣẹ rẹ pamọ.

Ko si ohun ti atannijẹ nla naa bẹru bii ki a ni oye nipa awọn ète rẹ. Lati le fi iwa ati erongba rẹ pamọ, o fi ara rẹ han ni ọna ti ko ni ṣe

ju lati mu ẹgan wa ti yoo si panilẹrin lọ. O tẹ lọrun daradara nigba ti a ba ya aworan rẹ bi ohun ti o ri ni lara tabi ti o panilẹrin, ti ko duro daradara, apakan eniyan ati apakan ẹranko. Inu maa rẹ dun nigba ti awọn ti wọn ro wipe wọn gbọn ti wọn si loye ba lo orukọ rẹ ninu awada ati yẹyẹ.

Nitori pe o ti fi ọgbọn arekereke fi ara rẹ pamọ ni o maa n jẹ ki a saba maa n bere wipe: “Ṣe iru ẹda bayi wa lootọ?” O jẹ ẹri aṣeyọri rẹ wipe awọn ẹlẹsin pupọ ni wọn gba ero ti o sọ ọrọ ti o farahan ninu Iwe Mimọ di oniro. Nitori wipe Satani le tete ṣe akoso iye awọn ti ko mọ nipa agbara rẹ ni ọrọ Ọlọrun fi fun wa ni ọpọlọpọ apẹẹrẹ nipa iṣẹ laabi rẹ, ti o n ṣi aṣọ kuro loju awọn agbara ikọkọ rẹ, ti a si n tipa eyi jẹ ki a ṣora fun igbejako rẹ.

Agbara ati arankan Satani ati awọn ogun rẹ i ba bawa lẹru daradara ti ki i ba ṣe wipe le ri aabo ati igbala ninu agbara Olurapada ti o ga julọ. A maa n fi pẹlẹkutu ti ile wa pẹlu kọkọrọ lati daabo bo ohun ini wa ati ẹmi wa kuro lọwọ awọn eniyan buburu; ṣugbọn a ki i saba maa n ronu wipe latigbadegba ni awọn angẹli buburu n wa ọna si ọdọ wa, ti a ko si ni agbara kankan ninu ara wa lati dojukọ igbejako wọn. Bi a ba gba wọn laaye, wọn le dawa niye ru, ki wọn ba ara wa jẹ ki wọn fiya jẹ wa, ki wọn ba ohun ini wa jẹ ati ẹmi wa pẹlu. Iparun ati ijiya nikan ni idunnu wọn. Ipo awọn ti wọn ko gba ọrọ Ọlọrun ti wọn jọwọ ara wọn fun idanwo Satani titi ti Ọlọrun fi fi wọn silẹ fun iṣakoso awọn ẹmi eṣu jẹ eyi ti o banilẹru. Ṣugbọn awọn ti wọn tẹle Kristi ni aabo nigbagbogbo labẹ aabo Rẹ. A n ran awọn angẹli ti wọn pọ ni agbara lati daabo bo wọn. Eṣu ko le da aabo ti Ọlọrun fi bo awọn eniyan Rẹ lu.

32

Awọn Idẹkun Satani

Ijakadi nla laarin Kristi ati Satani ti o ti bẹrẹ lati bi i ẹgbẹrun ọdun mẹfa seyin yoo pari laipẹ; eṣu n si n ṣe akitiyan rẹ ni ilọpo meji lati ko ibaku ba iṣẹ Kristi nitori eniyan ki o si de awọn ọkan mọ igbekun rẹ. Afojusun rẹ gan an ni lati ti awọn eniyan mọ inu okunkun ati aironupiwada titi ti ibalaja Olugbala a fi pari, ti ki yoo si ẹbọ fun ẹṣẹ mọ.

Nigba ti a ko ba ṣe akitiyan kankan lati doju kọ agbara rẹ, nigba ti aibikita ba gbilẹ kan ninu ijọ ati aye, Satani ko ni janpata nitori ko si ewu ati padanu awọn ti o n mu ni igbekun ninu ifẹ rẹ. Ṣugbọn nigba ti a ba pe akiyesi si ohun ayeraye, ti awọn ọkan si n beere pe, "Kini mo le ṣe lati le ri igbala?" yoo wa nibẹ lati fi agbara rẹ dan ti Kristi wo ki o si ṣiṣẹ tako agbara Ẹmi Mimọ.

Iwe Mimọ sọ fun wa nibi kan wipe, nigba ti awọn angẹli Ọlọrun pejọ lati fi ara wọn han niwaju Ọlọrun, Satani pẹlu wa laarin wọn (Jobu 1:6), ki i ṣe lati wa tẹriba niwaju Ọba Ayeraye, ṣugbọn lati le tẹsiwaju ninu iṣẹ buburu rẹ si awọn olododo ni. Pẹlu iru ero kan naa ni o fi maa n wa nibi ti awọn eniyan ba ti pejọ fun ijọsin Ọlọrun. Bi o tilẹ jẹ wipe oju eniyan ko ri, o n ṣiṣẹ pẹlu gbogbo itara lati dari iye awọn olujọsin. Bi ọlọgbọn jagunjagun ni o ṣe n ṣe eto rẹ silẹ. Bi o ti n ri ti iranṣẹ Ọlọrun n wa inu Iwe Mimọ, a fiye si koko ọrọ ti a fẹ ba awọn eniyan sọ. Yoo wa lo gbogbo alumọkọrọyi ati ayinike rẹ lati le dari awọn iṣẹlẹ debi pe iṣẹ iranṣẹ naa ko ni de ọdọ awọn ti o n tanjẹ lori koko ọrọ naa. A yoo pe ẹni ti o nilo ikilọ naa julọ si ibi ti a ti nilo iduro rẹ, tabi nipasẹ ọna miran a yoo di lọwọ lati gbọ ọrọ ti yoo jẹ òórùn ìyè sí ìyè fun.

Ẹwẹ, Satani ri ti iranṣẹ Oluwa kun fun ẹdun ọkan nitori okunkun ẹmi ti o yi awọn eniyan ka. O gbọ adura atọkanwa fun oore ọfẹ ọrun ati agbara lati ja ide aikọbiarasi, aibikita ati ọlẹ. Pẹlu itara tuntun á tẹsiwaju ninu ète rẹ. A dan awọn eniyan wo lati tẹ ara wọn lọrun nipa eyi, a sọ ifura wọn di oku debi pe wọn ko nile gbọ ohun gan ti wọn nilo lati kọ julọ.

Satani mọ daradara wipe ipenija oun yoo bori gbogbo awọn ti oun ba le dari lati kọ adura ati wiwa Iwe Mimọ silẹ. Nitori naa o wa gbogbo ete ti o ṣe e ṣe lati fi kun inu ọkan eniyan. Ẹgbẹ kan saba maa n wa ti wọn sọ wipe wọn ni iwabiọlọrun, ṣugbọn dipo ki wọn tẹsiwaju lati maa mọ otitọ, wọn sọ ọ di ẹsin wọn lati maa wa aṣiṣe ninu iwa tabi ibaku ninu igbagbọ awọn ti wọn kò jijọ fi ohun ṣọkan. Iru awọn wọnyi jẹ oluranlọwọ pataki fun Satani. Awọn olufisun awọn ara ko kere rara, wọn si maa n mura ṣiṣẹ ni nigba ti Ọlọrun ba n ṣiṣẹ ti awọn iranṣẹ Rẹ si n fun Un ni ijọsin tootọ. Wọn yoo ṣe afihan ọrọ ati iwa awọn ti wọn fẹran otitọ ti wọn si n ṣe igbọran si ni ọna ti ko tọ. Wọn yoo fi iranṣẹ Kristi ti n ṣiṣẹ tọkantọkan, ti o ni itara ti o ni ẹmi iseṣera ẹni han bi atannijẹ tabi ẹni ti a n tanjẹ. Iṣẹ wọn ni lati fi ero ọkan gbogbo iṣẹ otitọ ati iṣẹ rere han ni ọna ti ko tọ, wọn yoo ro ejọ eke, wọn yoo si ru ẹmi iṣọnilẹṣẹ ninu ọkan awọn alaimọkan soke. Ni gbogbo ọna ti wọn ba le gba, wọn a wa lati mu ki eyi ti o mọ ti o si jẹ ododo o fi ara han bi ohun aimọ ati eke.

Ṣugbọn a ko nilati tan ẹnikẹni jẹ nipa wọn. A le ri ni kiakia iru ọmọ ẹni ti wọn n ṣe, iru apẹẹrẹ ẹni ti wọn n tẹle ati iṣẹ ẹni ti wọn n ṣe. "Nipa awọn eso wọn ni ẹ o fi mọ wọn." Matiu 7:16. Iṣẹ wọn jọ ti Satani abanijẹ oloro, "olufisun awọn ara." Ifihan 12:10.

Atannijẹ nla naa ni ọpọlọpọ awọn aṣoju ti wọn ṣetan lati gbe orisirisi ẹtan kalẹ lati mu ọkan ni igbekun—ẹkọ odi ti a ṣeto rẹ lati ba ifẹ ati agbara ẹni ti o ba fẹ parun mu. O jẹ eto rẹ lati mu awọn alaiṣotitọ ti wọn ko ni iyipada wa sinu ijọ ti wọn yoo ru iyemeji ati aigbagbọ soke, ki wọn si ṣe idiwọ fun gbogbo ẹni ti o ba ni ifẹ lati ri wipe iṣẹ Ọlọrun tẹsiwaju, ti wọn si n fẹ tẹsiwaju pẹlu rẹ. Ọpọlọpọ ti wọn ko ni igbagbọ tootọ ninu Ọlọrun tabi ninu ọrọ Rẹ gbagbọ ninu awọn abala otitọ kan, eyi si sọ wọn di Kristẹni, nipasẹ eyi wọn ni agbara lati mu eke wa gẹgẹ bi ikọni Iwe Mimọ.

Igbagbọ wipe ohunkohun ti eniyan ba gbagbọ ko ṣe pataki jẹ ọkan lara itanjẹ Satani ti o n ṣiṣẹ julọ. O mọ wipe gbigba otitọ nitori pe a fẹran otitọ maa n ya ọkan ẹni ti o gba a si mimọ; nitori naa o n ṣiṣẹ ni gbogbo igba lati fi ero ti ko tọna, itan asan ati iyinrere miran rọpo. Lati ibẹrẹ wa awọn iranṣẹ Ọlọrun ti n jijadu pẹlu awọn ẹlẹkọ eke, ki i ṣe bi oniwa buburu nikan ṣugbọn bi ẹlẹkọ eke ti o lewu fun

ọkan. Elija, Jeremaya, Pọlu, pẹlu iduro gbọin ati aibẹru doju kọ awọn ti wọn n yi awọn eniyan pada kuro ninu ọrọ Ọlọrun. Iru ilawọ ti o ri gbogbo igbagbọ ẹsin tootọ bi eyi ti ko nitumọ ko ri aaye lọdọ awọn olugbeja otitọ wọnyi.

Itumọ Bibeli pẹlu ironu eniyan ni ọna ti ko lẹsẹ nilẹ, ati ọpọlọpọ ẹkọ ti wọn n tako ara wọn nipa ẹsin igbagbọ, ti a ri ninu ẹsin Kristẹni loni jẹ iṣẹ ọta nla nì lati dabaru ọkan awọn eniyan ki wọn ma ba a le mọ otitọ. Ainirẹpọ ati iyapa ti o wa laarin awọn ijọ Kristẹni loni waye latari aṣa ti o gbode kan ti i ṣe ti lilo Iwe Mimọ ni ọna ati gbè lẹyin ironu ti wọn fẹran. Dipo ki wọn kọ ẹkọ ọrọ Ọlọrun finifini pẹlu irẹlẹ ọkan lati le ni oye imọ Rẹ, ọpọlọpọ n wa lati ri ohun kan ti ko boju mu tabi ti o jẹ tuntun.

Lati le fi idi ikọni eke tabi aṣa ti ki i ṣe ti Kristẹni wọn mulẹ, awọn miran a mu ẹsẹ Iwe Mimọ kuro ninu ayika rẹ, tabi ki wọn lo aabọ ẹsẹ kan lati fi idi ero wọn mulẹ nigba ti abala iyoku a fihan wipe itumọ naa jẹ idakeji rẹ patapata. Pẹlu ọgbọn arekereke ejò, wọn a fi ẹsẹ ara wọn mulẹ si abẹ awọn ọrọ ti ko jọ ara wọn ti a sọ lati ba ero ọkan awọn ti ko yipada mu. Nipa eyi, ọpọlọpọ n mọọmọ ṣi ọrọ Ọlọrun lo. Awọn miran ti iye wọn sọji daradara, lo awọn apẹẹrẹ ati ami inu Iwe Mimọ, wọn tumọ wọn lati ba asan inu wọn pade, lainaani ẹri wipe oun ni olutumọ ara rẹ, wọn a wa gbe ero inu wọn kalẹ gẹgẹ bi ikọni Bibeli.

Nigbakugba ti a ba kọ ẹkọ Iwe Mimọ laisi adura, irẹlẹ ati ẹmi ti o ṣe e kọ, ẹsẹ ti o farahan kedere ti ko si ni wahala ati eyi ti o nira ni a o lọ lọrun kuro ninu itumọ wọn tootọ. Awọn adari ijọ padi yan awọn abala Iwe Mimọ ti o ba erongba wọn mu, wọn tumọ wọn lati tẹ ara wọn lọrun, wọn wa gbe eyi ka iwaju awọn eniyan, nigba ti wọn ko fun wọn ni anfani lati kọ ẹkọ Bibeli ki wọn si ni oye otitọ mimọ rẹ funra wọn. Gbogbo Bibeli ni o yẹ ki a fifunni gẹgẹ bi o ṣe wa. A dara fun wọn lati maṣe ni ikilọ Bibeli rara ju ki wọn ni ikọni Iwe Mimọ ti a ṣi tumọ pupọpupọ lọ.

A funni ni Bibeli lati jẹ atọna fun gbogbo ẹni ti o fẹ lati mọ ifẹ Ẹlẹda wọn. Ọlọrun fun awọn eniyan ni ọrọ asọtẹlẹ ti o daju; awọn angẹli, ani Kristi funra Rẹ wa lati sọ fun Danieli ati Johanu awọn ohun ti yoo ṣẹlẹ laipẹ. A ko fi awọn koko ọrọ pataki wọnni ti wọn ni i ṣe pẹlu igbala wa silẹ laiṣe itumọ wọn. A ko fi wọn han ni ọna ti yoo fi fa iporuuru ọkan lati le ṣi ẹni ti n wa otitọ tọkantọkan lọna. Oluwa sọ nipasẹ woli Habakuku pe: “Kọ iran naa silẹ, ki o si jẹ ki o han kedere, . . . ki ẹni ti o ka a le sare.” Habakuku 2:2. Ọrọ Ọlọrun han kedere si gbogbo ẹni ti o ba kọ pẹlu ọkan adura. Gbogbo ọkan ti o jẹ olootọ pẹlu ododo ni yoo wa si imọlẹ otitọ. “A funrugbin imọlẹ fun awọn

olododo.” O. Dafidi 97:11. Ko si ijọ kankan ti o le dagba ninu iwa mimọ laiṣe wipe awọn eniyan inu rẹ ba n fi tọkantọkan wa otitọ bi ohun alumọni ti o pamọ.

Pẹlu ariwo, ilawọ, awọn eniyan n fọ oju si awọn ete ọta wọn, nigba ti oun si n ṣiṣẹ nigba gbogbo lati ri afojusun rẹ. Bi o ti ṣe aṣeyọri ni fifi ironu eniyan rọpo Bibeli, a kọ ofin Ọlọrun silẹ, awọn ijọ si wa ni igbekun si ẹṣẹ nigba ti wọn n sọ wipe wọn wa ninu ominira.

Egun ni iwadi imọ ijinlẹ jẹ fun awọn miran. Ọlọrun gba ọpọ imọlẹ laaye lati tan si aye ninu awọn awari ninu imọ sayẹnsi ati ọgbọn; ani iyè ti o yè kooro julọ, ti ọrọ Ọlọrun ko ba tọ sọna ninu iwadi rẹ, yoo ṣina ninu akitiyan rẹ lati ṣe iwadi ibaṣepọ ti o wa laarin imọ ijinlẹ ati ifihan.

Oye eniyan nipa ohun ti ara ati ti ẹmi ko kun to, ko si pe; nitori idi eyi ọpọlọpọ ko le ri ibaṣepọ laarin ọrọ imọ sayẹnsi ati Iwe Mimọ. Ọpọlọpọ ni wọn gba ero ati idaba lasan gẹgẹ bi otitọ sayẹnsi, wọn si ro wipe a nilati dan ọrọ Ọlọrun wo pẹlu ikoni “ti a n fi eke pe ni imọ.” 1 Timoti 6:20. Ẹlẹda ati iṣẹ Rẹ kọja oye wọn; nitori ti wọn ko le ṣe alaye awọn nnkan wọnyi pẹlu ofin iṣẹda, wọn ri itan Bibeli bi eyi ti ko ṣe e fọkan tan. Awọn ti wọn ko fi ọkan tan awọn akọsilẹ Majẹmu Laelae ati Tuntun saba maa n tẹsiwaju lati ṣe iyemeji nipa iwalaaye Ọlọrun ti wọn si n fi agbara ainipẹkun fun iṣẹda. Nigba ti idakọro wọn ti sọnu, a fi wọn silẹ lati kọlu apata aigbagbọ.

Bayi ni ọpọ eniyan ṣe ṣina kuro ninu igbagbọ ti eṣu si ṣetan lati tan wọn jẹ. Awọn eniyan ṣe akitiyan lati gbọn ju Ẹlẹda wọn lọ; ọgbọn eniyan ti gbiyanju lati ṣe awari awọn ohun ijinlẹ, ki wọn si ṣe alaye awọn ohun ti a ko ni fihan laelae. Bi awọn eniyan ba maa wa ohun ti Ọlọrun ti fihan nipa ara Rẹ ati erongba Rẹ, ki wọn si ni oye rẹ, wọn i ba ri ogo ọla nla, ati agbara Jehofa ti i ba mu ki wọn ri bi wọn ti kere to ti wọn i ba si jẹ ki ohun ti a fihan o to fun wọn ati fun awọn ọmọ wọn.

Olubori itanjẹ Satani ni lati jẹ ki eniyan o maa wadi, ki o si maa ronu lori ohun ti Ọlọrun ko fihan, ti ko si fẹ ki o ye wa. Eyi ni o mu ki Lusifa o padanu ipo rẹ ni ọrun. O di alainitẹlọrun nitori pe a ko sọ gbogbo aṣiri eto Ọlọrun fun, ko si bọwọ fun gbogbo eyi ti a fihan nipa iṣẹ nla ti a gbe le lọwọ rara. Nipa riru ẹmi ainitẹlọrun kan naa soke ninu awọn angẹli ti wọn wa labẹ akoso rẹ, o fa isubu wọn. Bayii o n wa lati fi iru ẹmi yii sinu ọkan eniyan ki o si dari wọn lati maṣe bọwọ fun ofin Ọlọrun.

Awọn ti wọn ko fe gba otitọ pọnbele inu Bibeli n fi gbogbo igba wa arosọ ti yoo pa ẹri ọkan wọn lẹnu mọ. Bi ikọni ti a gbe kalẹ ko ba ti ṣe jẹ ti ẹmi to, bi ko ba ti ṣe nilo iṣẹra-ẹni ati irẹra-ẹni-silẹ to, bẹẹ ni wọn a ṣe fi gbogbo agbara gba a to. Awọn wọnyi n ba agbara ọpọlọ wọn jẹ lati sin ifẹkufẹ ara. Wọn ti gbọn ju ninu ero wọn lati wa inu Iwe

Mimọ pẹlu irẹlẹ ọkan ati adura tọkantọkan fun itọsọna Ọlọrun, wọn ko ni aabo kuro lọwọ itanjẹ. Satani ṣetan lati fun ọkan ni ohun ti o n fẹ, o si n fi itanjẹ le wọn lọwọ dipo otitọ. Bayi ni ijọ padi ṣe ni agbara lori ọkan awọn eniyan; nipa kikọ otitọ silẹ nitori ti o ni agbelebu, awọn Protestant n rin ọna kan naa. Gbogbo awọn ti wọn kọ ọrọ Ọlọrun silẹ lati wo irọrun ati iṣesi, ki wọn ma ba a wa ni ainirẹpọ pẹlu aye, yoo tẹwọgba ẹkọ odi patapata gbaa dipo otitọ ẹsin. Gbogbo eke ti a ba le ronu kan ni awọn ti wọn ba mọọmọ kọ otitọ silẹ yoo gba. Ẹni ti o ba fi ibẹru wo eke kan yoo gba omiran.

Apostoli Pọlu sọ nipa ẹgbẹ ti "ko gba ifẹ fun otitọ, ki a baa le gba wọn la," o sọ wipe: "Nitori idi eyi Ọlọrun yoo ran ẹtan lile si wọn, ki wọn ba le gba eke gbọ; ki gbogbo awọn ti ko gba otitọ gbọ, ṣugbọn ti wọn ni inu didun ninu aiṣododo le di ẹni èbé." 2 Tẹsalonika 2:10—12. Pẹlu iru ikilọ yii niwaju wa o yẹ ki a wa ni iṣọra nipa iru ikọni ti a n gba.

Lara awọn iṣọwọṣiṣẹ atannijẹ ti o ṣiṣẹ julọ ni ikọni ẹtan ati irọ agbayanu ti ibẹmilo. O fi ara pamọ bi angẹli imọlẹ, o n ta ẹwọn rẹ kalẹ si ibi ti a ko lero. Bi awọn eniyan yoo ba kọ ẹkọ Iwe Ọlọrun pẹlu adura atọkanwa ki wọn baa le ni oye rẹ, a ko ni fi wọn sinu okunkun lati gba ẹkọ eke. Ṣugbọn bi wọn ba ṣe n kọ otitọ silẹ, wọn di ẹran ijẹ fun èké.

Itanjẹ buburu miran ni ikọni ti ko gba Kristi ni Ọlọrun, ti o n sọ wipe ko wa laaye ṣaaju ki O to wa sinu aye yii. Awọn ẹgbẹ nla ti wọn sọ wipe wọn gba Bibeli gbọ fi oju rere wo ikọni yii; sibẹ o tako gbolohun kedere ti Olugbala wa sọ nipa ibaṣepọ Rẹ pẹlu Baba, iwabiọlọrun Rẹ, ati iwalaaye Rẹ ṣaaju ki O to wa saye. A ko le faaye gba a lailọ Iwe Mimọ lọrun lainidi. Ki i ṣe wipe o tabuku bi o ṣe yẹ ki a ri iṣẹ irapada nikan, ṣugbọn o jin igbagbọ wa ninu Bibeli gẹgẹ bi ifihan lati ọdọ Ọlọrun lẹsẹ. Nigba ti eleyi mu ki o lewu si, o tun jẹ ki o nira lati ṣe atako rẹ. Bi eniyan ba kọ ẹri Iwe Mimọ silẹ nipa bi Kristi ti jẹ Ọlọrun, lasan nipe a n ba wọn jiroro lori ọrọ naa, nitori ko si bi iṣọwọṣọrọ naa ti le lagbara to, wọn ko ni gbagbọ. "Eniyan ti ara ko le gba awọn ohun ti i ṣe ti Ẹmi Ọlọrun: nitori pe wọn je ohun alailọgbọn ni oju rẹ: bẹẹ ni oun ko si le mọ wọn, nitori pe nipa Ẹmi ni a fi n wadi wọn." 1 Kọrintin 2:14. Ko si ẹni ti o gba eke yii gbọ ti o le ni oye pipe nipa iwa tabi iṣẹ Kristi, tabi eto nla Ọlọrun fun irapada eniyan.

Ẹwẹ, eke miran ti o jẹ alarekereke, ti o tun nika ni igbagbọ ti o n tan kaakiri wipe ko si ẹda ti n jẹ Satani; wipe a tilẹ lo orukọ naa ninu Iwe Mimọ lati ṣe afihan ero ati ifẹ buburu inu eniyan lasan ni.

Ikọni ti a n waasu rẹ kikankikkan lati ori pẹpẹ iwaasu wipe ipadabọ Kristi lẹẹkeji ni wiwa si ọdọ enikọọkan nigba ti o ba ku, jẹ ete lati yi ọkan eniyan kuro ninu wiwa Rẹ ni eniyan ninu ikuuku awọsanma.

Fun ọpọ ọdun, Satani ti n sọ wipe, “Kiyesi, O wa ninu iyẹwu” (Matiu 24:23—26), ọpọlọpọ ọkan ni wọn si ti ṣegbe nipa gbigba ẹtan yii.

Ọgbọn aye kọni wipe adura ko ṣe pataki. Awọn akẹkọ sayẹnsi sọ wipe ko le si idahun tootọ si adura; wipe eyi yoo jẹ riru ofin, yoo jẹ iṣẹ iyanu, ko si sí ohun ti o n jẹ iṣẹ iyanu. Wọn sọ wipe ofin ti ko ṣe e yipada ni o n dari gbogbo agbaye ati wipe Ọlọrun funra Rẹ ko le tako awọn ofin yii. Wọn fi Ọlọrun han gẹgẹ bi Ẹni ti ofin ara Rẹ dè—a fi bi ẹnipe iṣọwọṣiṣẹ ofin Ọlọrun ko faaye gba ominira Ọlọrun. Iru ikọni yii tako ẹri Iwe Mimọ. Ṣe Kristi ati awọn apostoli Rẹ ko ṣe iṣẹ iyanu bi? Olugbala alaanu kan naa ṣi wa laaye loni, O si ṣetan lati tẹti si adura igbagbọ, gẹgẹ bi O ti ṣe nigba ti O n rin laarin awọn eniyan. Ohun ti ara n ṣiṣẹ pẹlu ti ẹmi. O jẹ ara eto Ọlọrun lati fun wa, ni idahun si adura igbagbọ, ohun ti ko le fun wa bi a ko ba beere.

Jantirẹrẹ ni awọn ẹkọ eke ati ero ti ko lẹsẹ nilẹ ti a n ri ninu awọn ijọ Kristẹni. Ko ṣe e ṣe lati ṣiro ewu buburu ti o maa n tẹle mimu ọkan lara awọn aala ti ọrọ Ọlọrun fi lelẹ kuro. Diẹ lara awọn ti wọn ṣe eyi duro pẹlu kikọ ẹyọ otitọ kan ṣoṣo silẹ. Ọpọlọpọ tẹsiwaju lati kọ awọn ikọni otitọ silẹ lẹyọkọọkan titi ti wọn fi di alaigbagbọ pọnbele.

Awọn eke inu awọn ikọni ti wọn gbajugbaja ti sọ ọpọlọpọ ọkan ti wọn i ba jẹ onigbagbọ ninu Iwe Mimọ di oniyemeji. Ko ṣe e ṣe fun lati gba awọn ikọni ti ko ba oye rẹ nipa ododo, aanu ati inu rere mu, nigba ti a si ṣe alaye awọn wọnyi gẹgẹ bi ikọni Bibeli, o kọ lati gba a gẹgẹ bi ọrọ Ọlọrun.

Ohun ti Satani fẹ gan ni eleyi. Ko si ohun ti o fẹ ju ki o ba igbagbọ eniyan jẹ ninu Ọlọrun ati ọrọ Rẹ lọ. Satani jẹ olori awọn ẹgbẹgun nla oniyemeji, o si n ṣiṣẹ pẹlu gbogbo agbara rẹ lati tan awọn ọkan jẹ sinu ẹgbẹ rẹ. O ti n di ohun ọlaju lati ṣe iyemeji. Ẹgbẹ nla kan wa ti wọn fi aifọkantan wo ọrọ Ọlọrun nitori idi kan naa ti wọn fi wo Ẹni ti o kọ ọ—nitori ti o ba ẹṣẹ wọn wi, o si ṣe idalẹbi rẹ. Awọn ti wọn ko ṣetan lati ṣe igbọran si ọrọ Rẹ n ṣe akitiyan lati bi aṣẹ rẹ wó. Wọn n ka Bibeli, tabi wọn n tẹti si ikọni rẹ bi a ti n sọ ọ lati ori pẹpẹ iwaasu lati le ri aṣiṣe ninu Iwe Mimọ tabi ninu iwaasu lasan ni. Ki i ṣe awọn diẹ ni wọn di alaigbagbọ nitori ati le da ara wọn lare tabi lati le ṣe awawi nitori ojuṣe ti wọn ko ṣe. Awọn miran di oniyemeji nitori igberaga ati ọlẹ. Wọn fẹran faaji pupọ titi ti wọn ko fi le ṣe ohunkohun ti a o fi bu ọla fun wọn, eyi ti o nilo akitiyan ati iṣẹra-ẹni, wọn n wọna lati ni okiki fun ọgbọn nipa bibu ẹnu atẹ lu Bibeli. Ọpọlọpọ nnkan ni oye eniyan, ti ọgbọn ọrun ko mọlẹ si, ko ni agbara lati mọ, nitori idi eyi wọn ri idi lati ṣe awawi. Ọpọ wa ti wọn ri bi ohun ti o dara lati duro ninu aigbagbọ, iyemeji ati jijẹ keferi. Ṣugbọn labẹ inu rere wọn, a o ri wipe idara-ẹni-loju ati igberaga ni o n ti wọn lati wuwa. Ọpọ

n fẹ lati ri ohun kan ninu Iwe Mimọ lati da ọkan ẹlomiran laamu. Awọn miran a kọkọ ṣe awawi, wọn a ronu ni ọna ti kotọ, nitori ti wọn fẹran ariyanjiyan. Wọn ko mọ wipe wọn n ti ara wọn bọ inu ikẹkun pẹyẹpẹyẹ ni. Nigba ti wọn si ti fi aigbagbọ wọn han, wọn ro wipe wọn nilati duro ninu ipo wọn. Nipa eyi wọn fi ọwọsowọpọ pẹlu awọn alaiwabiọlọrun wọn si ti ilẹkun Paradise mọ ara wọn.

Ọlọrun ti funni ni ẹri ti o to ninu ọrọ mimọ nipa imisi rẹ. A ṣe alaye kikun nipa awọn otitọ ti wọn ni i ṣe pẹlu irapada wa. Nipasẹ iranlọwọ Ẹmi Mimọ, eyi ti a ṣeleri fun gbogbo awọn ti wọn fi tọkantọkan wa, gbogbo eniyan le ni oye awọn otitọ wọnyi funra wọn. Ọlọrun ti fun awọn eniyan ni ipilẹ ti o lagbara ti wọn le gbe igbagbọ wọn le.

Sibẹ oye eniyan ko lagbara lati ni oye kikun nipa awọn eto ati erongba Ẹni Ailopin. A ko le ri Ọlọrun nipa iwadi laelae. A ko gbọdọ fi ọwọ ikugbu ṣi aṣọ loju iboju ti O fi bo ọlanla Rẹ. Apostoli sọ wipe: “Awamaridi ni idajọ Rẹ, ọna Rẹ si kọja ohun ti a n wari!” Romu 11:33. A le ni oye ibalo Rẹ pẹlu wa, ati idi ti o fi ṣe bẹ ẹ, ki a le ri ifẹ ati aanu ti ko lopin ti wọn sopọ mọ agbara ailopin. Baba wa ọrun n fi ọgbọn ati ododo dari ohun gbogbo, a ko si gbọdọ jẹ alainitẹlọrun ati alainigbẹkẹle, ṣugbọn ki a tẹriba tọwọtọwọ. Yoo fi eto Rẹ han wa ní bí ó ti dara fun wa lati mọ mọ, lẹyin eyi, a nilati gbẹkẹle Ọwọ ti o ni gbogbo agbara ati Ọkan ti o kun fun ifẹ.

Nigba ti Ọlọrun fun wa ni ọpọlọpọ idi lati gbagbọ, ko ni mu awawi fun aigbagbọ kuro lae. Gbogbo awọn ti n wa ohun ti wọn yoo fi iyemeji wọn kọ yoo ri. Ati awọn ti wọn kọ lati gba ati lati ṣe igbọran si ọrọ Ọlọrun titi ti a o fi dahun gbogbo ibeere, ti ko si ni si anfani fun iyemeji mọ ko ni wa si inu imọlẹ.

Ainigbẹkẹle ninu Ọlọrun jẹ ohun ti o boju mu fun ọkan ti a ko sọ dọtun, ti o wa ni iṣọta pẹlu Rẹ. Ṣugbọn Ẹmi Mimọ ni i mu igbagbọ wa, yoo si dagba bi a ti n nifẹ rẹ. Ko si ẹni ti o le jẹ alagbara ninu igbagbọ laisi iṣẹ atọkanwa. Aigbagbọ maa n lagbara si bi a ba ti n gba a laaye; bi awọn eniyan, dipo ki wọn duro lori ẹri tí Ọlọrun fifunni lati di igbagbọ wọn mu, ba gba ara wọn laaye lati maa beere ibeere, ki wọn si maa ṣe awawi eke, wọn a ri wipe awawi wọn a tubọ maa fẹsẹ mulẹ ni.

Ṣugbọn awọn ti wọn ṣeyemeji ninu awọn ileri Ọlọrun ti wọn ko gbẹkẹle idaniloju oore ọfẹ Rẹ n tabuku Rẹ; ipa wọn, dipo ki o fa awọn miran wa si ọdọ Kristi, saba maa n le wọn sa kuro ni ọdọ Rẹ ni. Wọn jẹ igi alaileso, ti wọn tan ẹka wọn kaakiri, ti wọn ko jẹ ki oorun o tan si awọn eweko miran, wọn rọ wọn si kú ni abẹ ojiji tutu. Iṣẹ aye awọn wọnyi duro gẹgẹ bi ẹri ti ko kaarẹ lati tako wọn. Wọn n gbin irugbin iyemeji ati aigbagbọ ti yoo mu ikore ti ko ni baku wa.

Ọna kan wa fun awọn tí wọn ko fẹ ni ohun kan ṣe pẹlu iyemeji lati inu ọkan wọn le rìn. Dipo ki wọn maa beere ki wọn si maa ṣe awawi eke nipa ohun ti ko ye wọn, jẹ ki wọn wo imọlẹ ti o n tan si ori wọn, wọn a si gba imọlẹ ti o tobi ju eyi lọ. Jẹ ki wọn ṣe ohun gbogbo ti o ye wọn, wọn yoo si ni agbara lati ni oye ati lati ṣe awọn ohun ti o n jẹ ki wọn ṣe iyemeji.

Satani le funni ni ayederu ti yoo jọ otitọ debi pe yoo tan awọn ti wọn ba fẹ jẹ, awọn ti wọn fẹ lati kọ iṣẹra-ẹni ati irubọ ti otitọ nilẹ silẹ; ṣugbọn ko ṣe e ṣe fun lati de ọkan kan ṣoṣo, ti o fi tọkantọkan fẹ lati mọ otitọ lai naani ohun ti yoo na, mọ abẹ agbara rẹ. Kristi ni otitọ ati "Imọlẹ, ti o mọlẹ si gbogbo ẹni ti o wa ninu aye." Johanu 1:9. A ti ran Ẹmi otitọ lati dari gbogbo eniyan sinu gbogbo otitọ. Pẹlu aṣẹ Ọmọ Ọlọrun a sọ wipe: "Ẹ wa kiri ẹyin yoo si ri." "Bi ẹnikẹni ba fẹ lati ṣe ifẹ Rẹ, yoo mọ ikọni Rẹ." Matiu 7:7; Johanu 7:17.

Awọn ohun perete ni awọn atẹle Kristi mọ nipa awọn ete ti Satani ati awọn ọmọ ogun rẹ n pa si wọn. Ṣugbọn Ẹni ti o joko ninu awọn ọrun yoo fagile gbogbo awọn ete wọnyi, yoo si jẹ ki wọn o ṣiṣẹ fun eto ijinlẹ Rẹ. Oluwa n gba awọn eniyan laaye lati ri wahala gbigbona ti idanwo, ki i ṣe nitori ti O ni inu didun si ijya ati ipọnju wọn, ṣugbọn nitori pe wọn nilo rẹ, fun iṣẹgun wọn nikẹyin. Ni ibamu pẹlu ogo Rẹ, ko le daabo bo wọn kuro ninu idanwo nitori pe idi fun idanwo ni lati pese wọn silẹ lati le doju ija kọ gbogbo itanjẹ buburu.

Awọn eniyan buburu tabi awọn ẹmi aimọ ko le di iṣẹ Ọlọrun lọwọ, bẹẹ ni wọn ko le di awọn eniyan Rẹ lọwọ lati de ọdọ Rẹ, bi wọn ba fẹ, pẹlu ọkan irẹlẹ ti o kaanu fun ẹṣẹ, lati jẹwọ ẹṣẹ wọn ki wọn si kọ wọn silẹ, ki wọn si fi igbagbọ di ileri Rẹ mu. Gbogbo idanwo, gbogbo agbara itako, boya ni gbangba tabi ni ikọkọ ni a le bori, "ki i ṣe nipa ipa tabi agbara, ṣugbọn nipa Ẹmi Mi ni Oluwa awọn ọmọ ogun wi." Sekaraya 4:6.

"Oju Oluwa wa lori awọn olododo, eti Rẹ si ṣi silẹ si adura wọn. . . . Tani yoo le ṣeyin nijamba, bi ẹyin ba n tẹle ohun ti o dara?" 1 Peteru 3:12, 13. Nigba ti Balamu, ẹni ti ileri ọrọ wọ loju, fẹ lo afọṣẹ si Israeli, ti o rubọ si Oluwa lati le fi awọn eniyan Rẹ gegun, Ẹmi Ọlọrun da ibi ti o fẹ sọ duro, Balamu si fi agidi kede: "Emi o ha ti ṣe fibu ẹni ti Ọlọrun ko fibu? tabi emi o ha ti ṣe fi ré ẹni ti Ọlọrun ko fi ré?" "Jẹ ki n ku iku olododo, si jẹ ki igbẹyin mi o dabi tirẹ!" Nigba ti o tun rubọ lẹẹkan si, woli alaiwabiọlọrun naa kede wipe: "Kiyesi mo ti gba aṣẹ lati sure: Oun si ti sure; emi ko si le yi pada. Oun ko ri ẹṣẹ ninu Jakọbu, bẹẹni ko ri iwa buburu ninu Israeli. Oluwa Ọlọrun rẹ wa pẹlu rẹ, ìhó Ọba si wa laarin rẹ." "Nitootọ ko si asasi kan ti o le ran Jakọbu, bẹẹni ko si afọṣẹ ti o le ran Israeli: Nisinsinyii ni a o maa wi niti Jakọbu ati Israeli

pe, Ohun ti Ọlọrun ti ṣe!” Sibẹ ni ẹẹkẹta a tun to awọn pẹpẹ, Balamu tun pete lati gegun. Ṣugbọn Ẹmi Ọlọrun kede ibukun awọn eniyan Rẹ lati ẹnu woli ti ko fẹ soọ, o si ba iwa omugọ ati arankan ọta wọn wi: “Alabukun ni fun ẹni ti o bukun fun ọ, egun si ni fun ẹni ti o fi ọ gegun.” Numeri 23:8, 10, 20, 21, 23; 24:9.

Ni akoko yii awọn eniyan Israeli jẹ olootọ si Ọlọrun; niwọn igba ti wọn si tẹsiwaju ninu igbọran si ofin Rẹ, ko si agbara ninu aye tabi ni ọrun apaadi ti o le bori wọn. Ṣugbọn egun ti a ko gba Balamu laaye lati fi wọn ré ni o ṣe aṣeyọri lati mu wa sori wọn nipa titan wọn sinu ẹṣẹ. Nigba ti wọn ru ofin Ọlọrun, wọn ya ara wọn nipa kuro ni ọdọ Rẹ, a si fi wọn silẹ lati ni imọlara agbara apanirun.

Satani mọ daju wipe ẹgbẹgun okunkun ko le doju kọ ọkàn ti o jẹ alaarẹ julọ ti o ba wa ninu Kristi, ati pe bi o ba yọ ara rẹ sita, a o doju kọ, a o si ṣẹgun rẹ. Nitori naa o n wa ọna lati fa awọn ọmọ ogun agbelebu kuro ni ibi aabo wọn, nigba ti o fi awọn agbara rẹ dènà de wọn, o si ṣetan lati pa ẹnikẹni ti o ba wọ inu ilẹ rẹ run. Ninu igbara le Ọlọrun pẹlu irẹlẹ nikan, ati igbọran si gbogbo ofin Rẹ ni a ti le ri aabo.

Ko si ẹni ti o ni aabo fun ọjọ kan tabi wakati kan laisi adura. Ni pataki julọ, o yẹ ki a ṣipẹ si Ọlọrun fun ọgbọn lati ni oye ọrọ Rẹ. Nibi ni a ti fi itanjẹ adanniwo, ati ọna ti a file bori rẹ pẹlu aṣeyege han. Satani jẹ amoye ninu kika Iwe Mimọ, tí á si ṣe itumọ awọn ẹsẹ rẹ bi o ti fẹ, nipasẹ eyi ti o ro lati gbe wa ṣubu. A nilati kọ Bibeli pẹlu irẹlẹ ọkan, ki a maṣe gbagbe wipe a nilati gbe ara le Ọlọrun. Nigba ti a nilati ṣọra fun awọn ete Satani nigba gbogbo, a nilati maa gbadura pẹlu igbagbọ loorekoore pẹlu: “Maṣe tì wa sinu idanwo.”

33

Itanjẹ Nla Akọkọ

Lati ibẹrẹ itan eniyan ni Satani ti bẹrẹ iṣẹ rẹ lati tan iran wa jẹ. Ẹni ti o bẹrẹ iṣọtẹ ni ọrun fẹ lati so awọn olugbe aye yii pọ mọ ara rẹ ninu ijakadi rẹ pẹlu ijọba Ọlọrun. Adamu ati Efa ni idunu pipe ninu igbọran si ofin Ọlọrun, eyi si jẹ ẹri atigbadegba lati tako ohun ti Satani sọ ni ọrun, wipe ofin Ọlọrun n pọnni loju ko si dara fun rere awọn ẹda Rẹ. Siwaju si, ilara Satani ru soke bi o ti ri ile daradara ti a pese fun tọkọtaya alailẹṣẹ naa. O pinnu lati fa isubu wọn, wipe lẹyin ti a ba ti ya wọn nipa kuro ni ọdọ Ọlọrun ti o si fi wọn si abẹ agbara rẹ tan, aye yoo jẹ ohun ini rẹ, yoo si tẹ ijọba rẹ dó sibi ni atako si Ẹni Giga julọ.

Bi Satani ba fi ara rẹ han gẹgẹ bi iwa rẹ ti rí ni, wọn i bá ti le pada sẹyin, nitori ti a ti ki Adamu ati Efa nilọ nipa ọta ti o lewu yii; ṣugbọn o n ṣiṣẹ ninu okunkun, o n fi erongba rẹ pamọ, ki o ba le ri iṣẹ rẹ ṣe daradara. O lo ejò bi ohun elo, nigba naa o jẹ ẹda ti o dun un wò loju, o ba Efa sọrọ: “Njẹ Ọlọrun sọ wipe, Ẹ ko gbọdọ jẹ ninu gbogbo eso ọgba?” Jẹnẹsisi 3:1. Bi o ba ṣe wipe Efa kọ lati ba oludanwo naa ṣe ariyanjiyan ni, i ba wa ni ailewu; ṣugbọn o ba dọrẹ, o si ṣubu sinu itanjẹ rẹ. Bayi ni a si ṣe n bori ọpọlọpọ. Wọn ṣe iyemeji, wọn si n ṣe ariyanjiyan nipa ofin Ọlọrun; dipo ki wọn ṣe igbọran si aṣẹ Ọlọrun, wọn gba ero eniyan eyi ti o fi itanjẹ Satani pamọ.

“Obirin naa sọ fun ejo naa pe, A le jẹ ninu awọn eso igi ọgba: ṣugbọn eso igi ti o wa ni aarin ọgba ni Ọlọrun sọ pe, Ẹyin ko gbọdọ jẹ ninu rẹ, bẹẹ si ni ẹyin ko gbọdọ fi ọwọ kan an, ki ẹ ma baa ku. Ejo naa si sọ fun obirin naa, Ẹyin ki yoo ku ikukiku kan: nitori ti Ọlọrun mọ wipe ni ọjọ ti ẹyin ba jẹ ninu rẹ, nigba naa ni oju yin yoo la, ẹ o si

da bi Ọlọrun, ni mimọ rere ati buburu." Ẹsẹ 2—5. O sọ wipe wọn yoo dabi Ọlọrun, wọn a ni ọgbọn ti o pọ ju ti tẹlẹ lọ wọn a si le gbé igbesi aye ti o dara si. Efa ṣubu sinu idanwo; nipasẹ agbara rẹ, a mu Adamu dẹṣẹ. Wọn gba ọrọ ejo wipe Ọlọrun ko ni ṣe ohun ti O sọ, wọn ko gbẹkẹle Ẹlẹda wọn, wọn si ro wipe O n dí ominira wọn lọwọ ati wipe wọn le ni ọgbọn nla ati igbega nipa riru ofin Rẹ.

Ṣugbọn kini Adamu, lẹyin ẹṣẹ rẹ, ri wipe o jẹ itumọ ọrọ yii, "Ni ọjọ ti ẹyin ba jẹ ninu rẹ, kiku ni ẹyin yoo ku?" Njẹ o ri wipe o tumọ si ohun ti Satani jẹ ki wọn gbagbọ, wipe yoo mu wọn wọnu igbesi aye ti o ga si? À bá sọ wipe rere nla wà lati jere ninu ẹṣẹ, a ba si sọ wipe Satani ni ẹni ti o ṣe iran wa loore. Ṣugbọn Adamu ko ri eyi gẹgẹ bi itumọ ọrọ Ọlọrun. Ọlọrun sọ wipe gẹgẹ bi ijiya fun ẹṣẹ rẹ, eniyan yoo pada sinu ilẹ nibi ti a ti mu jade wa: "Erupẹ saa ni iwọ, iwọ o si pada di erupẹ." Ẹsẹ 19. Awọn ọrọ Satani, "Oju yin yoo la," jẹ ootọ ni abala kan ṣoṣo yii pe: Lẹyin ti Adamu ati Efa ṣe aigbọran si Ọlọrun, oju wọn ṣi silẹ lati ri iwa omugọ wọn; wọn mọ ibi wọn si jẹ eso kikoro ti aigbọran.

Ni aarin ọgba ni igi iye wa, eyi ti eso rẹ ni agbara lati muni wa laaye titi lae. Bi Adamu ba tẹsiwaju lati jẹ olugbọran si Ọlọrun ni, i ba ri aye, laisi idena si igi yii, i ba si wa laaye titi lae. Ṣugbọn nigba ti o dẹṣẹ, a ko gba a laaye lati jẹ ninu igi iye, o si di ẹni ti o n ku. Ọrọ Ọlọrun wipe, "Erupẹ ni iwọ, iwọ yoo si pada di erupẹ," tọka si aisi ẹmi rara.

Aiku, ti a ṣeleri fun eniyan bi o ba ṣe igbọran, ni o padanu nipasẹ aigbọran. Adamu ko le fun awọn ọmọ rẹ ni ohun ti ko ni; ki ba ti si ireti fun iran ti o ṣubu yii bi Ọlọrun ko ba mu aiku wa si arọwọto wọn nipasẹ irubọ Ọmọ Rẹ. Nigba ti "iku kọja sori gbogbo eniyan, nitori gbogbo eniyan ni o saa ti ṣẹ," Kristi "fi iye ati aiku han nipasẹ iyinrere." Romu 5:12; 2 Timoti 1:10. Nipasẹ Kristi nikan ṣoṣo ni a fi le ni aiku. Jesu sọ wipe: "Ẹni ti o ba gbagbọ ninu Ọmọ o ni iye ainipẹkun: ẹni ti ko ba si gba Ọmọ gbọ ki yoo ri iye." Johanu 3:36. Gbogbo eniyan ni o le ni ibukun ti a ko le diyele yii bi wọn yoo ba ṣe awọn ohun ti o beere fun. Gbogbo "awọn ti n fi suuru tẹsiwaju ninu iṣẹ rere n wa ogo ati ọla ati aiku," yoo gba "iye ainipẹkun." Romu 2:7.

Ẹnikan ṣoṣo ti o ṣeleri iye fun Adamu ninu aigbọran ni atanniję nla naa. Ọrọ ti ejo naa sọ fun Efa ni Edẹni—"Ẹyin ki yoo ku ikukiku kan"—ni iwaasu akọkọ ti a ṣe lori aiku ọkan eniyan. Sibẹ, gbolohun yii, ti o duro lori aṣẹ Satani nikan ṣoṣo, ni a n gbọ lori pẹpẹ iwaasu awọn Kristẹni, ti ọpọlọpọ eniyan si n gba a witiwiti bi awọn obi wa akọkọ ti gba a. Ọrọ mimọ ti o wipe, "Ọkan ti o ba ṣẹ ni yoo ku" (Isikiẹli 18:20), ni a tumọ si: Ọkan ti o ba ṣẹ ki yoo ku, ṣugbọn yoo wa titi lae. O ya wa

lẹnu lati ri ifẹ ajeji ti o n mu ki ọkan eniyan o gbagbọ ninu ọrọ Satani ti wọn si jẹ alaigbagbọ ninu ọrọ Ọlọrun.

Bi o ba ṣe wipe eniyan ni anfani lati de ibi igi iye lẹyin ti o ṣubu ni, i ba wa laaye titi lae, bayi ni ẹṣẹ i ba ṣe wa titi lae pẹlu. Ṣugbọn awọn kerubu pẹlu ida ina ṣọ "ọna ti o lọ si ibi igi iye" (Jẹnẹsisi 3:24), ko si si ọkan ninu idile Adamu ti a gba laaye lati kọja idena yii lati le jẹ ninu eso ti n funni ni iye yii. Nitori naa, ko si ẹlẹṣẹ ti o wa laaye titi.

Ṣugbọn lẹyin iṣubu, Satani rọ awọn angẹli rẹ lati ṣe akitiyan pataki lati kọni ni igbagbọ wipe pẹlu bi a ṣe da eniyan, ko le ku; nigba ti a si ti mu ki eniyan o gba eke yii, a mu ki wọn gbagbọ wipe ẹlẹṣẹ yoo gbe titi lae ninu ijiya. Ọmọ alade okunkun n ṣiṣẹ nipasẹ awọn aṣoju rẹ, o n fi Ọlọrun han gẹgẹ bi onroro ti o fẹ gbẹsan ni sisọ wipe gbogbo awọn ti ko ṣe ifẹ Rẹ ni O n dàsí ọrun apaadi, yoo mu ki wọn mọ ibinu Oun nigba ti wọn ba n jẹrora ti a ko le fẹnu sọ ti wọn n runra ninu ina ayeraye, Ẹlẹda wọn a wo wọn pẹlu itẹlọrun.

Bayi ni ọta nla nì ṣe fi iwa rẹ ṣe alaye Ẹlẹda ati Oninurere fun gbogbo eniyan. Satani ni o ni iwa ika. Ifẹ ni Ọlọrun; ohun gbogbo ti O da mimọ, ailabawọn, ati daradara ni ki oluṣọtẹ nla akọkọ to mu ẹṣẹ wa. Satani funra rẹ ni ọta ti o n dan eniyan wo lati dẹṣẹ, yoo wa paarun bi o ba le ṣe bẹẹ; nigba ti ọwọ rẹ ba ba ẹni ti n jiya lọwọ rẹ tan, inu rẹ a dun nitori iparun ti o mu wa. Bi a ba gba a laaye, a rọ gbogbo aye yii da sinu awọn rẹ. Bi ki i ba n ṣe nitori iranlọwọ agbara Ọlọrun ni, ko si ọmọkunrin tabi ọmọbinrin Adamu ti i ba sa asala.

Satani n wọna lati bori awọn eniyan loni, gẹgẹ bi o ti bori awọn obi wa akọkọ, nipa mímu igbẹkẹle wọn ninu Ẹlẹda wọn ki o si dari wọn lati ṣeyemeji nipa ọgbọn ijọba Rẹ ati ododo awọn ofin Rẹ. Satani ati awọn aṣoju rẹ fi Ọlọrun han bi ẹni ti o buru ju awọn funra wọn lọ, lati le da iwa ika ati iṣọtẹ wọn lare. Atanniję nla naa n ṣe akitiyan lati ti iwa ika rẹ si ori Baba wa ọrun, ki o le fi ara rẹ han gẹgẹ bi ẹnipe a ṣẹ ẹ nipa lile kuro ni ọrun nitori pe o kọ lati ṣe igbọran si adari ti ko dara. O fi ominira ti wọn a gbadun labẹ iṣakoso rere oun han araye, ni idakeji si ihamọ ti ofin onroro Jehofa fini si. Ni ọna yii o ṣe aṣeyọri lati tan awọn ọkan jẹ kuro ninu igbọran wọn si Ọlọrun.

Ikọni wipe a n jẹ awọn ẹni buburu ti wọn ti ku niya pẹlu ina ati sulfuru ninu ina ọrun apaadi ti n jo titi lae ti tako ero wa nipa ifẹ ati aanu, ani idajọ tó; wipe fun ẹṣẹ igba perete ti wọn gbe ninu aye, wọn yoo jiya inira titi ti Ọlọrun a fi wa laaye. Sibẹ, a n kọni ni ẹkọ yii kaakiri, o si maa n wa ninu ijẹwọ igbagbọ ọpọ ijọ ẹsin Kristẹni. Ọmọwe ninu ẹkọ nipa Ọlọrun kan sọ wipe: "Ijiya inu ina apaadi a mu ki inu awọn eniyan mimọ o dun titi lae. Nigba ti wọn ba ri awọn miran ti wọn ni iṣẹda kan naa, ti a bi sinu ipo kan naa, ninu iru ijiya bayii, ti a si wa

yà wọn sọtọ, yoo jẹ ki wọn mọ bi inu wọn ti dun to." Omiran sọ bayii: "Nigba ti idajọ idalẹbi ba n lọ titi lae lori awọn ohun elo ibinu, eefin ijiya wọn a maa lọ soke niwaju awọn ohun elo aanu titi lae, dipo ki wọn wa ninu awọn ohun elo ijiya yii, wọn a sọ pe, Amin, Aleluya, ẹ yin Oluwa."

Nibo ninu ọrọ Ọlọrun ni a tile ri iru ikọni yii? Ṣe awọn ti a rapada ni ọrun a padanu gbogbo ero ikẹdun ati ikaanu ati ero wipe eniyan ni gbogbo wa ni? Ṣe wọn a padanu awọn nnkan wọnyi lati le fi ainikẹdun tabi onroro ika rọpo ni? Rara, rara o; eyi ki i ṣe ikọni Iwe Ọlọrun. Awọn ti wọn sọ ayọka to wa loke yẹn le jẹ ọmọwe ati olotitọ eniyan, ṣugbọn a tan wọn jẹ nipa arekereke Satani. O dari wọn lati ṣi ọrọ ti o han kedere ninu Iwe Mimọ tumọ, wọn n fun ni alaye ikoro ati ika ti ki i ṣe ti Ẹlẹda wa bikoṣe ti ara rẹ. "Bi mo ti wa laaye ni Oluwa wi, Emi ko ni inu didun ninu iku ẹlẹṣẹ, ṣugbọn ki ẹlẹṣẹ o yipada kuro ninu ọna rẹ ki o si ye: ẹ yipada, ẹ yipada kuro ninu ọna buburu yin, eese ti ẹyin o fi ku?" Isikiẹli 33:11.

Kini Ọlọrun a jere bi a ba gba wipe inu Rẹ dun si iriri ijẹniniya ti ko lopin, wipe inu Rẹ a dun ti o ba gbọ irora, igbe gooro, ati egun awọn eda ti n jiya ti O fi sinu ina apaadi? Ṣe awọn ariwo ti o banilẹru wọnyi le jẹ orin ni eti Ifẹ Ailopin? A n sọ wipe fifi awọn ẹlẹṣẹ jiya ailopin yoo fi bi Ọlọrun ti korira ẹṣẹ han gẹgẹ bi iwa ibi ti o le ko ibajẹ ba ayọ ati eto inu gbogbo agbaye. Ha, isọrọ odi yii ti buru to! A fi bi ẹnipe ikorira Ọlọrun fun ẹṣẹ ni yoo jẹ idi ti yoo fi wa titi lae. Nitori gẹgẹ bi ikọni awọn ẹlẹkọ nipa Ọlọrun yii, ijiya ailopin laisi ireti aanu yoo bi awọn ti a n jẹ niya ninu, bi wọn si ti n fi ibinu wọn han pẹlu egun ati ọrọ odi, bẹẹ ni a maa fikun ẹru ẹbi wọn titi aye. Fifikun ẹṣẹ titi aye ko fi ogo fun Ọlọrun.

O kọja agbara oye eniyan lati ṣiro ibi ti ẹkọ odi ijiya titi lae yii ti fa. Ẹsin Bibeli, ti o kun fun ifẹ ati iwa rere, ti o pọ ni ikaanu, ni a fi aimọkan ṣu okunkun bo ti a si wọ ni aṣọ ẹru jẹjẹ. Nigba ti a ba wo ọna eke ti Satani gba lati fi iwa Ọlọrun han, njẹ o yẹ ki o ya wa lẹnu idi ti a fi n bẹru, paya, ti a tun n korira Ẹlẹda alaanu wa? Igbagbọ nipa Ọlọrun gẹgẹ bi Ẹni ti O panilaya ti o tan kaakiri gbogbo aye lati ara ikọni lati ori pẹpẹ iwaasu ti sọ ọpọlọpọ di oniyemeji ati alaigbagbọ.

Igbagbọ ijiya ayeraye jẹ ọkan lara awọn ẹkọ eke ti wọn para pọ di ọti waini irira Babiloni, eyi ti o mu ki gbogbo orilẹ ede mu ninu rẹ. Ifihan 14:8; 17:2. Wipe awọn iranṣẹ Kristi le gba ẹkọ odi yii ki wọn tun waasu rẹ lati ori pẹpẹ mimọ jẹ ohun ijinlẹ lootọ. Wọn gba a lati ọdọ Romu gẹgẹ bi wọn ti gba ọjọ isinmi eke. Lootọ awọn eniyan nla ati eniyan rere ti fi kọni; ṣugbọn imọlẹ lori koko ọrọ yii ko tan si wọn gẹgẹ bi o ti tan si wa. Wọn ni ojuṣe fun imọlẹ ti o tan ni akoko wọn;

a ni ojuṣe fun eyi ti o tan ni akoko wa. Bi a ba yiju kuro ni ara ẹri ọrọ Ọlọrun, ti a wa gba ẹkọ eke nitori pe awọn baba wa fi kọni, a ṣubu si abẹ idalẹbi ti a ṣe sori Babiloni, a n mu ninu waini irira rẹ.

Ẹgbẹ nla kan wa ti ikọni ijiya ainipẹkun yii ko ni irira, ti wọn si bọ sinu aṣiṣe miran ni idakeji. Wọn ri wipe Iwe Mimọ ṣe alaye Ọlọrun gẹgẹ bi Ẹni ti o kun fun ifẹ ati aanu, wọn ko si le gbagbọ wipe yoo ju awọn ẹda ọwọ Rẹ sinu ina ajooku ọrun apaadi. Ṣugbọn ni gbigbagbọ wipe ọkan ko le ku, wọn ko ri ọna miran ju ki wọn gbagbọ wipe gbogbo eniyan ni a o gbala nikẹyin lọ. Ọpọ ni wọn ri awọn ikilọ Bibeli gẹgẹ bi ohun ti a ṣe lati dẹruba awọn eniyan lati le ṣe igbọran lasan ati wipe wọn ko ni wa si imuṣẹ bi a ti sọ ọ. Nipa eyi ẹlẹṣẹ le maa gbe ninu faaji imọti-ara-ẹni-nikan, ki o ma ka aṣẹ Olorun si, sibẹ ki o maa reti lati ri oju rere nikẹyin. Iru ikọni yii ti o tẹ aanu Ọlọrun loju, ṣugbọn ti ko bikita nipa ododo Rẹ, tẹ ọkan ti ko ni iyipada lọrun, o si n jẹ ki ẹlẹṣẹ o tẹsiwaju ninu ẹṣẹ.

Lati fihan bi awọn onigbagbọ ninu igbala gbogbo eniyan ti lọ Iwe Mimọ lọrun lati fi idi ikọni ti n pa ọkan run wọn mulẹ, o ṣe pataki ki a ka ninu ọrọ wọn. Nibi isinku ọdọmọkunrin ti ko lẹsin kan, ti o ku lọgan ninu ijamba kan, oniwaasu ti o gbagbọ ninu igbala gbogbo aye kan kà lati inu Iwe Mimọ gẹgẹ bi ẹṣẹ rẹ, ọrọ kan nipa Dafidi: “O si gba ipẹ ni ti Amnoni: o saa ti ku.” 2 Samuẹli 13:39.

Oniwaasu naa sọ pe, “A saba maa n bi mi leere wipe, kini yoo jẹ atubọtan awọn ti wọn ku ninu ẹṣẹ boya ninu iwa ọmuti, ti wọn ku pẹlu abawọn iwa ọdaran ti a ko fọ mọ kuro ninu aṣọ wọn, tabi ti wọn ku bi ọdọmọkunrin yii ti ku laijẹwọ tabi jẹ igbadun iriri ẹsin. A faramọ Iwe Mimọ; idahun rẹ yoo mu iṣoro nla naa kuro. Amnoni jẹ ẹlẹṣẹ paraku; ko ronupiwada, a rọ ọ ni ọti yo, ninu ipo yii si ni a ti pa a. Dafidi jẹ woli Ọlọrun, o gbọdọ mọ boya yoo dara fun Amnoni tabi ko ni dara fun ninu aye ti n bọ. Ki ni o wa ninu ọkan rẹ? ‘Ọkan ọba Dafidi si fa gidigidi si Absalomu: nitori o ti gba ipẹ ni ti Amnoni: o saa ti ku.’ Ẹsẹ 39.

“Kini a wa le fayọ lati inu ede yii? Ṣe ki i ṣe wipe ijiya ailopin ko si lara igbagbọ ẹsin rẹ bi? Bẹẹ ni a ṣe ro; nibi a ri idahun iṣẹgun ni atilẹyin fun ẹkọ ti o dunmọni ninu julọ, ti o ni ilalọyẹ julọ, ti o si ṣeni loore julọ ti iwa mimọ ati alaafia gbogbo aye nikẹyin. O gba ipẹ nitori pe ọmọ rẹ ti ku. Ki lo de ti o fi ri bẹ? Nitori pe pẹlu oju aṣọtẹlẹ o wo ọjọ iwaju ti o logo, o si ri ọmọ naa ti o jinna rere si gbogbo idanwo, a yọ kuro ninu igbekun a si fọ ọ mọ kuro ninu idibajẹ ẹṣẹ, lẹyin ti a sọ ọ di mimọ, ti a si laalọyẹ tan, a gba a si awujọ awọn ẹmi ti wọn ti goke lọ ti n yọ. Itunu rẹ kan ṣoṣo ni wipe, ni mimu kuro ninu aye ẹṣẹ ati ijiya yii, ọmọ rẹ ti o fẹran ti lọ si ibi ti eemi Ẹmi Mimọ ti o dara

julọ a ti mi si ọkan ti o ṣokunkun, nibi ti iye rẹ a ti ṣi si ọgbọn ọrun ati idunnu ifẹ ailopin, nipa eyi, a pese rẹ silẹ pẹlu ara ti a ti ya si mimọ lati le jẹgbadun isinmi ati awujọ ajogunba ti ọrun.

"Ninu awọn ero yii a fẹ ki a mọ wipe igbala ọrun ko duro lori ohunkohun ti a le ṣe ninu aye yii; boya lori ọkan ti a ti yipada nisinsinyii, tabi igbagbọ ti isinsinyii, tabi igbagbọ ninu ẹsin ti isinsinyii."

Bayi ni ẹni ti o pe ara rẹ ni iranṣẹ Kristi ṣe n ṣe atunsọ irọ ti ejo naa pa ni Edẹni: "Ẹyin ki yoo ku ikukiku kan." "Ni ọjọ naa ti ẹyin ba jẹ ninu rẹ, oju yin yoo la, ẹyin yoo si dabi Ọlọrun." O sọ wipe eyi ti o buru julọ ninu awọn ẹlẹṣẹ—apaniyan, ole, ati alagbere—yoo ri atunṣe lẹyin iku lati le wọ inu igbadun ainipẹkun.

Nibo ni ayi-Iwe Mimọ lọrun yii ti ri idahun rẹ? Lati inu ẹṣẹ kan ṣoṣo ti o sọ nipa bi Dafidi ti gba f'Ọlọrun. Ọkan rẹ "fa si Absalomu gidigidi; nitori ti o gba ipẹ ni ti Amnoni, nitori ti o ti ku." Nigba ti akoko ti sẹ ẹdun ọkan rẹ ro, ero rẹ yi kuro lati ara oku wa si alaaye ọmọ ti o sa kuro nile funra rẹ nitori ibẹru ijiya ti o tọ si iwa ọdaran rẹ. Eyi jẹ ẹri wipe, aba-ọmọ-baba-ẹni-sun, ọmuti Amnoni ti lọ si ibi igbadun lọgan lẹyin iku rẹ, nibi ti a o ti fọ ọ mọ ti a o si pese rẹ silẹ fun ibapejọpọ awọn angẹli alailẹṣẹ! Arosọ didun ni lootọ lati tẹ ọkan ti ko yipada lọrun! Ikọni Satani funra rẹ ni eleyi, o si n ṣe ifẹ rẹ daradara. Njẹ o yẹ ki o yawa lẹnu wipe iwa ibajẹ pọ si pẹlu iru iwaasu bayii?

Ohun ti ẹlẹko eke yii ṣe jẹ apẹẹrẹ ohun ti ọpọ awọn miran maa n ṣe. A yọ ẹṣẹ diẹ ninu Iwe Mimọ kuro ni aye wọn, eyi ti i ba fihan wipe itumọ wọn yatọ patapata si eyi ti wọn fun; iru awọn ẹṣẹ ti a le yẹ lẹṣẹ bayi ti a lọ lọrun ni a wa n lo lati gbe ikọni ti ko ni ipilẹ ninu ọrọ Ọlọrun lẹṣẹ. Ẹri ti a lo lati fi sọ wipe Amnoni ọmuti wa ni ọrun jẹ eyi ti o tako gbolohun Iwe Mimọ ti o han kedere wipe ko si ọmuti kan ti yoo jogun ijọba Ọlọrun. 1 Kọrintin 6:10. Bayi ni awọn oniyemeji, alaigbagbọ ati oniyemeji ẹsin ṣe n yi otitọ pada di irọ. Ti a si n tan ọpọlọpọ jẹ nipasẹ arekereke wọn ti a si jẹ ki wọn sun sinu aabo ẹran ara.

Bi o ba jẹ otitọ wipe ọkan gbogbo eniyan n lọ taara si ọrun lẹyin iku, i ba jẹ ohun ti o dara bi a ba feran iku ju ki a wa laaye lọ. Ọpọlọpọ ni ikọni yii ti mu ki wọn ṣe iku pa ara wọn. Nigba ti wahala, idamu ati ijakulẹ ba bo wọn mọlẹ, o dabi ẹnipe ohun ti o rọrun ni lati da ẹmi ẹni legbodo ki eniyan si goke lọ sinu igbadun aye ainipẹkun.

Ọlọrun ti funni ni ẹri ti a ko le ṣe aṣiṣe rẹ ninu ọrọ Rẹ wipe oun yoo jẹ awọn ti wọn ru ofin Rẹ niya. Awọn ti wọn sọ ọrọ didun si ara wọn wipe O jẹ alaanu ju ki O ṣe idajọ lori ẹlẹṣẹ lọ tilẹ nilati wo agbelebu Kalfari lasan ni. Iku Ọmọ Ọlọrun alailabawọn jẹri si wipe "iku ni ere ẹṣẹ," wipe gbogbo titẹ ofin Ọlọrun loju ni yoo gba idajọ ti o tọ si.

Kristi ti ko lẹṣẹ di ẹṣẹ fun eniyan. O ru ẹbi ẹṣẹ, bi Baba Rẹ ti gbe oju Rẹ pamọ kuro ni ọdọ Rẹ titi ti ọkan Rẹ fi bajẹ, ti O si ku, a ṣe gbogbo irubọ yii ki a baa le ra ẹlẹṣẹ pada. Ko si ọna miran ti a fi le da eniyan lare kuro ninu ijiya ẹṣẹ. Gbogbo ọkan ti o ba si kọ lati kopa ninu iwẹnumọ ti a ti ṣe pẹlu ohun iyebiye naa yoo funra rẹ ru ẹbi ati ijiya ẹṣẹ.

Ẹ jẹ ki a wò siwaju si ohun ti Bibeli fi kọni nipa awọn alaiwabiọlọrun ati awọn ti ko ronupiwada, awọn ti ẹni ti o gbagbọ ninu igbala gbogbo aye fi si ọrun gẹgẹ bi angẹli mimọ, alayọ.

“Emi yoo fun ẹni ti ongbẹ n gbẹ lati inu orisun omi iye lọfẹ.” Ifihan 21:6. Awọn ti ongbẹ ba n gbẹ nikan ni a ṣe ileri yii fun. Awọn ti wọn ba mọ wipe wọn nilo omi iye nikan, ti wọn wa laika ohun miran si ni a o fifun. “Ẹni ti o ba ṣẹgun ni yoo jogun ohun gbogbo; Emi yoo si jẹ Ọlọrun rẹ, oun yoo si jẹ ọmọ Mi.” Ẹsẹ 7. Nibi pẹlu, a ṣe alaye ojuṣe eniyan. Lati le jogun ohun gbogbo, a nilati doju ija kọ ẹṣẹ, ki a si ṣẹgun rẹ.

Oluwa sọ nipasẹ woli Aisaya wipe: “Sọ fun olododo wipe yoo dara fun.” “egbe ni fun ẹni ibi! ki yoo dara fun: nitori ti a o fi ere iṣẹ ọwọ rẹ fun.” Aisaya 3:10, 11. “Bi ẹlẹṣẹ ba wuwa buburu ni ọgọrun igba,” ọlọgbọn ni sọ wipe, “ti o si wa laaye fun igba pipẹ, sibẹ, mo mọ daju wipe yoo dara fun awọn ti wọn bẹru Ọlọrun, ti wọn bẹru niwaju Rẹ: ṣugbọn ki yoo dara fun eniyan buburu.” Oniwaasu 8:12, 13. Pọlu pẹlu jẹri wipe ẹlẹṣẹ n pa “ibinu mọ” fun ara rẹ “di ọjọ ibinu ati ifihan idajọ ododo Ọlọrun; Ẹni ti yoo fun olukuluku gẹgẹ bi iṣẹ rẹ;” “wahala ati iporuuru ọkan fun gbogbo ọkan ti o ba wuwa buburu.” Romu 2:5, 6, 9.

“Ko si alagbere, tabi alaimọ, tabi oloju kokoro, ti i ṣe abọriṣa, ti yoo ni ipin kan ninu ijọba Kristi ati ti Ọlọrun wa.” Efesu 5:5. “Ẹ maa lepa alaafia pẹlu gbogbo eniyan, ati iwa mimọ laisi eyi, ko si ẹni ti yoo ri Oluwa.” Heberu 12:14. “Ibukun ni fun awọn ti wọn ṣe ofin Rẹ ki wọn le ni ẹtọ si igi iye, ki wọn si le gba ẹnu ọna wọ inu ilu naa. Nitori ni ita ni awọn aja, ati oṣo, ati alagbere, ati apaniyan, ati abọriṣa, ati gbogbo ẹni ti o fẹran ti o si n ṣe eke gbe wa.” Ifihan 22:14, 15.

Ọlọrun ti fi iwa Rẹ ati ọgbọn ti yoo fi mu ẹṣẹ kuro nilẹ han eniyan. “Oluwa Ọlọrun, alaanu ati oloore ọfẹ, onipamọra ti o pọ ni oore ati otitọ, ti n pa aanu mọ fun ẹgbẹẹgbẹrun, ti n dari aiṣedeede ati irekọja ati ẹṣẹ ji, ti ki yoo si jẹ ki ẹlẹbi o lọ lọfẹ.” Eksodu 34:6, 7. “Gbogbo awọn eni ibi ni yoo parun.” “Ṣugbọn awọn onirekọja ni a o parun pọ: opin awọn eniyan buburu ni a o ge kuro.” O. Dafidi 145: 20; 37:38. A o lo agbara ati aṣẹ ijọba Ọlọrun lati ṣe iṣọtẹ rọ; sibẹ gbogbo idajọ ni yoo wa ni ibamu pipe pẹlu iwa Ọlọrun gẹgẹ bi alaanu, onipamọra ati oloore ọfẹ.

Ọlọrun ko ni fi ipa mu ẹnikẹni. Ko ni inudidun si ki a ṣe igbọran bi ẹru. O fẹ ki ẹda ọwọ Rẹ o fẹran Oun nitori pe O tọ si ifẹ rẹ. A fẹ ki wọn fẹran Oun nitori pe wọn ni oye ọgbọn, ododo ati aanu Oun. Gbogbo awọn ti wọn ba si ni oye ti o tọ nipa awọn iwa wọnyi a fẹran Rẹ nitori pe a fa wọn sọdọ Rẹ nitori ti wọn fẹran awọn iwa yii.

Ipilẹ iwa ti inu rere, aanu ati ifẹ ti Olugbala wa fi kọni ti o si fi ara han ninu iwa Rẹ jẹ ifihan ifẹ ati iwa Ọlọrun. Kristi sọ wipe Oun ko kọni ni ohun kan ayafi eyi ti Oun gba lati ọdọ Baba. Ipilẹ ijọba Ọlọrun wa ni ibamu pẹlu ilana Olugbala, “Ẹ fẹran awọn ọta yin.” Ọlọrun ṣe idajọ lori awọn ẹni buburu nitori rere gbogbo agbaye ni, ani fun rere awọn ti a ṣe idajọ Rẹ le lori. I ba mu inu wọn dun bi O ba le ṣe bẹẹ ni ibamu pẹlu ofin ijọba ati ododo iwa Rẹ. O fi apẹẹrẹ ifẹ Rẹ yi wọn ká, o fun wọn ni oye ofin Rẹ, O si n fi ipe aanu Rẹ tẹle wọn kiri; ṣugbọn wọn kẹgan ifẹ Rẹ, wọn sọ ofin Rẹ di asan, wọn si kọ aanu Rẹ silẹ. Nigba ti wọn n gba ẹbun Rẹ nigba gbogbo, wọn n tabuku Ẹni ti n funni ni ẹbun; wọn korira Ọlọrun nitori ti wọn mọ wipe O korira ẹṣẹ wọn. Oluwa fi ara da iwa aitọ wọn fun igba pipẹ, ṣugbọn akoko ipinu yoo de nikẹyin, ti a o ṣe ipinu lori gbogbo atubọtan wọn. Ṣe yoo wa so awọn ọlọtẹ yii mọ ẹgbẹ Rẹ bi? Ṣe yoo fi ipa mu wọn lati ṣe ifẹ Rẹ?

Awọn ti wọn ti yan Satani gẹgẹ bi adari wọn, ti o si jẹ wipe agbara rẹ ni o n dari wọn ko ṣetan lati wa siwaju Ọlọrun. Igberaga, ẹtan, ainiwọntuwọnsi, iwa ika ti duro sinu iwa wọn. Ṣe wọn le wọ ọrun lati gbe titi lae pẹlu awọn ti wọn ti gàn, ti wọn si korira ninu aye bi? Oniruọ ko le wa ni ibamu pẹlu otitọ laelae, irẹlẹ ko ni tẹ ikara-ẹni-si ati igberaga lọrun, iwa mimọ ko le fi ara da iwa ibajẹ, ifẹ ainimọ-ti-ara-ẹni-nikan ko le wu ifẹ ti ara-ẹni-nikan. Iru orisun igbadun wo ni ọrun le fun awọn ti wọn ti fi ara wọn jin fun ifẹ aye ati imọ-ti-ara-ẹni-nikan?

Ṣe a le dede gbe awọn ti wọn gbe igbesi aye wọn ni iṣọtẹ si Ọlọrun sinu ọrun lati ri iwa pipe ati iwa mimọ to n gbe nibẹ,—gbogbo ọkan ti o kun fun ifẹ, gbogbo oju ti o n tan pẹlu ayọ, ti orin didun si n lọ soke fun iyin Ọlọrun ati Ọdọ Aguntan, ti ọwọ imọlẹ ailopin n tan si ori awọn ti a gbala lati oju Ẹni ti o joko si ori itẹ,—ṣe ọkan awọn ti o kun fun ikorira Ọlọrun, otitọ ati iwa mimọ, le darapọ mọ awọn ero ọrun lati kọ orin iyin wọn? Ṣe wọn le fi ara da ogo Ọlọrun ati ti Ọdọ Aguntan? Rara, rara: a fun wọn ni akoko aanu, ki wọn fi le ni iwa ọrun; ṣugbọn wọn ko kọ ọkan wọn lati ni ifẹ iwa mimọ; wọn ko kọ ede ọrun, bayii o ti pẹ ju. Igbesi aye iṣọtẹ si Ọlọrun ko jẹ ki wọn yẹ fun ọrun. Iwa ailabawọn rẹ, iwa mimọ ati alaafia rẹ yoo jẹ ijiya fun wọn; ogo Ọlọrun yoo jẹ ina ajonirun. Wọn a fẹ lati sa kuro ni ibi mimọ naa. Wọn a fẹran iparun, ki a ba le pa wọn mọ kuro ni oju Ẹni ti o ku lati ra wọn pada. Awọn eniyan buburu ni wọn funra wọn yan

atubọtan wọn. Bi a ko ti ṣe gba wọn si ọrun jẹ ohun ti wọn yan funra wọn, eyi si jẹ ipinu ododo ati aanu bi a ba wo o lati ọdọ Ọlọrun.

Bi àgbàrá ikun omi, ina ọjọ nla naa kede idajọ Ọlọrun wipe awọn ẹni buburu ko ṣe e wosan. Wọn ko ni iwa lati tẹriba fun aṣẹ Ọlọrun. Wọn lo ifẹ wọn fun iṣọtẹ, nigba ti aye si pari, o ti pẹ ju fun wọn lati yi iṣọwọronu wọn pada si idakeji, lati yipada kuro ninu irekọja si igbọran, lati inu ikorira si ifẹ.

Ni dida Keeni apaniyan si, Ọlọrun fun araye ni apẹẹrẹ ohun ti yoo jẹ ayọrisi dida ẹlẹṣẹ si lati tẹsiwaju ninu igbesi aye aisedeede lainijanu. Nipasẹ ikọni ati apẹẹrẹ Keeni, a dari ọpọlọpọ awọn ọmọ rẹ sinu ẹṣẹ titi ti "iwa buburu eniyan fi pọ lori ilẹ aye" ti "gbogbo ero inu ọkan rẹ si jẹ kiki da ibi lojojumọ." "Aye pẹlu ti dibajẹ niwaju Ọlọrun, aye si kun fun iwa ipa." Jẹnẹsisi 6:5, 11.

Ninu aanu si aye, Ọlọrun pa awọn eniyan buburu rẹ rẹ ni akoko Noah. Ninu aanu, O pa awọn oniwa ibajẹ ninu Sodomu run. Nipasẹ agbara itanjẹ Satani awọn ti n ṣiṣẹ ẹṣẹ n ri ikaanu ati igboriyin, bayi ni wọn ṣe n dari awọn miran sinu iṣọtẹ. Bi o ṣe ri niyi ni akoko Keeni ati Noah, ati ni akoko Abrahamu ati Lọti, bẹẹ ni o ṣe ri ni akoko wa. Ninu aanu si gbogbo aye ni Ọlọrun yoo pa awọn ti wọn kọ oore ọfẹ Rẹ silẹ run nikẹyin.

"Iku ni ere ẹṣẹ; ṣugbọn ẹbun ọfẹ Ọlọrun ni iye ainipẹkun nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa." Romu 6:23. Nigba ti iye jẹ ipin awọn olododo, iku ni ipin awọn ẹni buburu. Mose sọ fun awọn ọmọ Israeli wipe: "Mo gbe ire ati iye, iku ati ibi ka iwaju yin loni." Deutaronomi 30:15. Iku ti a n sọ nibi ki i ṣe eyi ti a pe sori Adamu, nitori gbogbo eniyan ni o n jiya ijiya irekọja rẹ. "Iku keji" ni, eyi ti a gbe kalẹ ni atako si iye ainipẹkun.

Ni ayọrisi si ẹṣẹ Adamu, iku rekọja wa sori gbogbo eniyan. Gbogbo eniyan ni wọn n kọja lọ sinu iboji. Ati nipasẹ ipese eto igbala, a o mu gbogbo eniyan jade wa lati inu iboji wọn. "Ajinde oku yoo wa, ati ti olododo ati ti alaisododo;" "nitori ninu Adamu gbogbo eniyan n ku, bẹẹ gẹgẹ, ninu Kristi a o sọ gbogbo eniyan di alaaye." Iṣe 24:15; 1 Kọrintin 15:22. Ṣugbọn a ṣe iyatọ si aarin awọn ẹgbẹ mejeeji ti a mu jade wa. "Gbogbo awọn ti wọn wa ninu iboji yoo gbọ ohùn Rẹ, wọn yoo si jade wa; awọn ti wọn ṣe rere, si ajinde iye; ati awọn ti wọn ṣe buburu si ajinde idalẹbi." Johanu 5:28, 29. Awọn ti a "ka yẹ" fun ajinde iye jẹ "alabukun fun ati mimọ." "Ni ori awọn wọnyi, iku keji ko lagbara." Ifihan 20:6. Ṣugbọn awọn ti ko ri idariji gba nipasẹ ironupiwada ati igbagbọ yoo gba ijiya irekọja—"ere ẹṣẹ." Wọn yoo jiya ti o yatọ si ara wọn ni pipẹ ati ni bi o ti lagbara to, "gẹgẹ bi iṣẹ wọn," ṣugbọn ni ikẹyin, yoo yọri si iku keji. Nigba ti ko ṣe e ṣe fun Ọlọrun, ni ibamu pẹlu idajọ ati aanu Rẹ, lati gba ẹlẹṣẹ la ninu ẹṣẹ rẹ,

O mu ẹmi rẹ kuro eyi ti irekọja rẹ mu ki o padanu, ati eyi ti oun funra rẹ fihan wipe ko tọ si oun. Onkọwe ti a misi kan sọ pe: “Ni igba diẹ si, awọn eniyan buburu ki yoo si: bẹẹni iwọ yoo wá àyè rẹ finifini, ki yoo si si.” Omiran tun sọ pe: “Wọn yoo dabi ẹnipe wọn ko wa laaye ri.” O. Dafidi 37:10. Obadaya 16. Pẹlu ẹgan ti o yi wọn ka, wọn a tẹri sinu okunkun ayeraye laini ireti.

Bayi ni ẹṣẹ yoo ṣe pari, pẹlu gbogbo iṣoro ati iparun ti o ti ipa rẹ wa. Onisaamu sọ wipe: “Iwọ pa awọn eniyan buburu run, Iwọ pa orukọ wọn rẹ lae ati laelae. Ah iwọ ọta, iparun de opin ayeraye.” O. Dafidi 9:5, 6. Johanu ninu Ifihan wo ọjọ iwaju ni igba ainipẹkun, o gbọ orin iyin ni gbogbo agbaye ti ko si si idiwọ kan. A gbọ ti gbogbo ẹda ni ọrun ati aye n fi ogo fun Ọlọrun. Ifihan 5:13. Ko ni si ọkan ti o ṣegbe kankan ti yoo tabuku Ọlọrun bi o ti n yan ninu ijiya ailopin; ko si ẹni abuku kan ninu ina apaadi ti yoo da igbe rẹ pọ mọ orin awọn ẹni ti a gbala.

Lori aṣiṣe wipe a da eniyan pẹlu aiku ni ikọni wipe eniyan mọ nnkan ninu iku duro le lori—ikọni bi i ti ijiya ainipẹkun, ti o tako awọn ikọni Iwe Mimọ, ti o tako ironu eniyan, ati imọlara wa gẹgẹ bi eniyan. Gẹgẹ bi igbagbọ ti o wọpọ, awọn ti a ra pada ni ọrun mọ gbogbo ohun ti n ṣẹlẹ lori ilẹ aye paapa julọ nipa igbesi aye awọn ọrẹ wọn ti wọn fi silẹ. Ṣugbọn bawo ni yoo ṣe jẹ orisun ayọ fun awọn ti wọn ti ku lati mọ wahala awọn alaaye, lati ri ẹṣẹ ti awọn ti wọn fẹran n da, ki wọn si ri bi wọn ti n fi ara da gbogbo ibanujẹ, ijakulẹ, ati irora aye yii? Igbadun melo ni awọn ti n rababa lori awọn ọrẹ wọn laye a maa gbadun ni ọrun? Igbagbọ wipe lọgan ti eemi ba ti fi ara silẹ, a a sọ ọkan alaigbagbọ sinu ina ọrun apaadi ti ṣi ni lara to! Irora ọkan awọn ti wọn n ri ọrẹ wọn ti n kọja lọ sinu iboji ni aimurasilẹ, lati wọ inu ayeraye idamu ati ẹṣẹ a ti pọ to! Ọpọ ni wọn ti di aṣiwere nitori ero ayọnilẹnu yii.

Kini Iwe Mimọ sọ nipa awọn nnkan wọnyi? Dafidi sọ wipe eniyan ko mọ nnkankan ninu ipo oku. “Eemi rẹ jade lọ, o pada di erupẹ rẹ: ni ọjọ naa gan ni ero rẹ ṣegbe.” O. Dafidi 146:4. Solomoni ṣe iru ijẹri kan naa: “Alaaye mọ wipe oun yoo ku: ṣugbọn oku ko mọ ohun kan.” “Ifẹ wọn, ati ikorira wọn, ati arankan wọn ti ṣegbe; bẹẹ ni wọn ko ni ini kankan mọ titi aye ninu ohun gbogbo ti a n ṣe labẹ ọrun.” “Ko si iṣẹ tabi ète tabi imọ tabi ọgbọn ninu ipo oku, nibi ti iwọ n lọ.” Oniwaasu 9:5, 6, 10.

Ni idahun si adura rẹ, nigba ti a fi ọdun marundinlogun kun igbesi aye Isikaya. Ọba naa fi imoore rẹ han nipa kikọ orin iyin si Ọlọrun fun aanu nla Rẹ. Ninu orin rẹ, o sọ fun wa idi ti oun fi n yọ bẹẹ: “Iboji ko le fi iyin fun Ọ; iku ko le ṣe iranti Rẹ: awọn ti wọn n lọ sinu koto ko le

reti fun otitọ Rẹ. Alaaye, alaaye, ni yoo yin Ọ, bi mo ti n ṣe loni yii." Aisaya 38:18, 19. Igbagbọ ti o wọpọ loni fi awọn oku olododo han bi ẹnipe wọn wa ni ọrun, wọn wọ inu adun, wọn si n yin Ọlọrun pẹlu ahọn ainipẹkun; ṣugbọn Isikaya ko le ri iru anfani ologo yii ninu iku. Ẹri ọrọ Onisaamu wa ni ibamu pẹlu ọrọ rẹ wipe: "Ko si iranti Rẹ ni iku: ninu isa oku tani yoo fi iyin fun Ọ?" "Awọn oku ki i yin Oluwa, tabi ẹni ti o ba lọ si ibi idakẹrọrọ." O. Dafidi 6:5; 115:17.

Peteru ni ọjọ Pẹntikọsti sọ wipe Dafidi "ti ku a si ti sin, iboji rẹ si wa pẹlu wa loni." "Nitori Dafidi koi ti i goke re ọrun." Iṣe 2:29, 34. Wipe Dafidi si wa ninu iboji titi di ọjọ ajinde fihan wipe awọn olododo ko lọ si ọrun lẹyin iku. Nipasẹ ajinde nikan, ati nitori pe Jesu jinde nikan ni Dafidi ṣe le joko ni ọwọ ọtun Ọlọrun nikẹyin.

Pọlu tun sọ wipe: "Bi awọn oku ko ba ji dide, nigba naa ni Kristi ko ji dide: bi Kristi ko ba si ji dide, lasan ni igbagbọ yin, ẹyin si wa ninu ẹṣẹ yin. Awọn pẹlu ti wọn sun ninu Kristi si ṣègbé." 1 Kọrintin 15:16—18. Bi awọn olododo ba n lọ taara si ọrun nigba ti wọn ba ku, fun bi ẹgbẹrun ọdun mẹrin seyin, bawo ni Pọlu ṣe le sọ wipe bi ko ba si ajinde, "awọn pẹlu ti wọn sun ninu Kristi ṣegbe"? A ba ma nilo ajinde mọ.

Ajẹriku Tyndale, n sọ nipa ipo oku wipe: "Mo jẹwọ ni gbangba wipe, emi ko gbagbọ wipe wọn wa ninu ogo kikun tí Kristi wa ninu rẹ, tabi ti awọn angẹli Ọlọrun ti a yan wa ninu rẹ. Bẹẹ ni ko si ninu kókó igbagbọ mi kankan; nitori bi o ba jẹ bẹẹ, a jẹ wipe iwaasu ajinde ti ara a jẹ ohun asán."

O jẹ ohun ti o han kedere wipe ireti ibukun ainipẹkun ninu iku ti jẹ ki a kọ ikọni ajinde ti Bibeli silẹ pupọpupọ. Irufẹ yii ni Ọmọwe Adam Clarke sọrọ le lori, o sọ pe: "Ikọni ajinde dabi ẹnipe o ṣe pataki jọjọ laarin awọn Kristẹni akọkọ ju bi o ti ri loni lọ! Bawo ni o ṣe ri bẹẹ? Awọn apostoli n tẹnumọ nigba gbogbo, wọn si n rọ awọn atẹle Ọlọrun lati ṣaapọn, lati ṣe igbọran ati lati ni inu didun nitori rẹ. Awọn ti wọn tẹle wọn ni akoko yii ki i saba n mẹnu ba a! Bẹẹ ni awọn apostoli ṣe iwaasu, bẹẹ si ni wọn gbagbọ; bẹẹ ni awa waasu, bẹẹ si ni awọn olugbọ wa gbagbọ. Ko si ikọni kan ninu iyinrere ti a tẹnumọ julọ; bẹẹ ni ko si si ikọni kan ninu iwaasu akoko yii ti a ṣe aibikita si julọ!"

Eyi tẹsiwaju titi ti otitọ ologo ti ajinde fi fẹrẹ farasin ti awọn Kristẹni si fi fẹrẹ gbagbe rẹ patapata. Onkọwe aṣaaju ẹsin kan sọrọ lori ọrọ Pọlu ni 1 Tẹsalonika 4:13—18, o wipe: "Fun gbogbo idi fun itunu, ikọni ti aiku onibukun awọn olododo ti rọpo ikọni ti o le fa iyemeji ti wiwa Oluwa lẹẹkeji ni ọdọ wa. Nigba ti a ba ku, Oluwa wá fun wa.

Ohun ti o yẹ ki a duro ki a si maa ṣọna fun ni eyi. Awọn oku ti kọja lọ sinu ogo na. Wọn ko duro de ohùn kakaki fun idajọ ati ibukun wọn."

Ṣugbọn nigba ti O fẹ fi awọn ọmọlẹyin Rẹ silẹ, Jesu ko sọ fun wọn wipe wọn yoo wa si ọdọ Oun ni aipẹ. "Mo n lọ pese aye silẹ fun yin," ni O wi. "Bi mo ba si lọ pese aye silẹ fun yin, Emi yoo pada wa, lati gba yin si ọdọ Emi tikalara Mi." Johanu 14:2, 3. Pọlu tun sọ fun wa siwaju si pe "Oluwa funra Rẹ yoo sọkalẹ wa lati ọrun pẹlu ariwo, pẹlu ohun Olori angẹli, ati pẹlu kàkàkí Ọlọrun; awọn oku ninu Kristi ni yoo kọ jinde; nigba naa ni awa ti a wà laaye ti o ku lẹyin yoo lọ pade wọn ninu ikuuku awọsanma, lati pade Oluwa ninu afẹfẹ: bẹẹ ni a o si maa wa pẹlu Oluwa titi lae." O tun fi kun wipe: "Ẹ maa fi awọn ọrọ wọnyi tu ara yin ninu." 1 Tẹsalonika 4:16—18. Awọn ọrọ itunu wọnyi ti yatọ patapata si ti alufa ti o gbagbọ wipe gbogbo aye ni a o gbala ti a ṣe atunsọ rẹ ni akọkọ nì tó! O tu awọn ọrẹ ti wọn padanu eniyan wọn ninu pẹlu idaniloju pe, bi o ti wu ki ẹṣẹ oku o pọ to, nigba ti o ba mí eemi ikẹyin nibi, a o gba si aarin awọn angẹli. Pọlu tọka awọn arakunrin rẹ si wiwa Oluwa ni ọjọ iwaju, nigba ti a o ja ẹwọn iboji ti awọn "oku ninu Kristi" a si jinde si iye ainipẹkun.

Ki ẹnikẹni to le wọ inu ibugbe awọn alabukun fun, a nilati ṣe ayẹwo ẹjọ wọn, a nilati ṣe ayẹwo iwa ati iṣe wọn niwaju Ọlọrun. Gbogbo eniyan ni a o ṣe idajọ rẹ gẹgẹ bi awọn ohun ti a kọ sinu awọn iwe, ti a o si fi ere fun wọn gẹgẹ bi iṣẹ wọn ti ri. Idajọ yii ko ni waye nigba ti eniyan ba ku. Ẹ kiyesi ọrọ Pọlu: "O ti yan ọjọ kan, ninu eyi ti yoo ṣe idajọ aye ninu ododo nipasẹ Ọkunrin naa, Ẹni ti O ti yan; O si ti fun gbogbo eniyan ni idaniloju lori eyi, nipa jiji dide kuro ninu oku." Iṣe 17:31. Nibi apostoli naa sọ ọ ni kedere wipe a ti yan ọjọ kan, nigba naa ni ọjọ iwaju, fun idajọ aye.

Judah sọ nipa akoko kan naa. "Awọn angẹli ti wọn ko duro ni ipo wọn, ṣugbọn ti wọn fi ibugbe wọn silẹ ni o pamọ sinu ẹwọn ayeraye ninu okunkun di idajọ ọjọ nla." O tun lo ọrọ Enoku wipe: "Kiyesi Oluwa n bọ wa pẹlu ẹgbẹẹgbẹrun awọn ẹni mimọ Rẹ, lati ṣe idajọ lori gbogbo eniyan." Juda 6, 14, 15. Johanu sọ wipe oun "ri awọn oku, ẹni kekere ati ẹni nla, duro niwaju Ọlọrun; a si ṣi awọn iwe silẹ: . . . a si ṣe idajọ awọn oku lati inu awọn ohun ti a kọ sinu iwe naa." Ifihan 20:12.

Ṣugbọn bi awọn oku ba ti n jẹgbadun irọrun ni ọrun bayi tabi ki wọn maa jẹrora ninu ina ọrun apaadi, kini idajọ ọjọ iwaju wulo fun? Awọn ikọni ọrọ Ọlọrun lori awọn koko ọrọ pataki yii ko farasin, bẹẹ ni wọn ko tako ara wọn; eniyan lasan le ni oye wọn. Ṣugbọn oye ti o yè kooro wo ni o le ri ọgbọn tabi ododo ninu iṣọwọronu ti o wa nisinsinyii? Ṣe awọn olododo, lẹyin ayẹwo ẹjọ wọn ni idajọ a gba

igboriyin, “Ku iṣẹ iwọ iranṣẹ rere ati olootọ: . . . wọ inu ayọ Oluwa Ọlọrun rẹ,” nigba ti wọn ti n gbe ni iwaju Rẹ ná, boya wọn tilẹ ti n gbe fun ọdun pipẹ? Ṣe a a pe awọn eniyan buburu lati ibi idaloro lati gba idajọ Onidajọ aye: “Ẹ kuro lọdọ Mi, ẹyin ẹni egun, sinu ina ainipẹkun”? Matiu 25:21, 41. Ah, yẹyẹ ti o banilẹru! Yiyẹ ọgbọn ati ododo Ọlọrun lulẹ ni ọna ti o doju tini!

Igbagbọ nipa aiku ọkan jẹ ọkan lara awọn ẹkọ eke Romu, ti o wa lati inu ẹsin ibọrisa, ti a mu wọ inu ẹsin Kristẹni. Martin Luther ka a mọ ara “awọn itan arosọ ti o lodi si iwa ẹda ti o jẹ ara ààtàn awọn ofin Romu.” Ni sisọrọ lori ọrọ Solomoni ninu Oniwaasu, wipe oku ko mọ ohun kan, Alatunṣe naa sọ pe: “Ibomiran ti o fihan wipe awọn oku ko ni imọ kan. O sọ pe, ko si iṣe, ko si imọ, ko si oye, ko si ọgbọn nibẹ. Solomoni ri wipe awọn oku n sun, wọn ko sì mọ ohun kankan rara. Nitori ti awọn oku sun silẹ, laika ọjọ tabi ọdun, ṣugbọn nigba ti wọn ba ji a dabi ẹnipe wọn ko sun pe iṣẹju kan.”

Ko si ibi kan ninu Iwe Mimọ ti a ti ri wipe awọn olododo n lọ si ibi èrè wọn tabi awọn ẹni buburu n lọ si ibi ijiya wọn nigba ti wọn ba ku. Awọn baba ati awọn woli ko fi iru idaniloju yii silẹ. Kristi ati awọn apostoli Rẹ ko tilẹ sọ ohun ti o jọ ọ. Bibeli fi kọni ni kedere wipe awọn oku ko lọ si ọrun lọgan ti wọn ba ku. A fi wọn han wipe wọn n sun titi di ọjọ ajinde. 1 Tẹsalonika 4:14; Jobu 14:10—12. Ni ọjọ naa gan ti okùn fadaka tu ti ọpọn wura si fọ (Oniwaasu 12:6), ero eniyan parẹ. Awọn ti wọn lọ sinu iboji wa ni idakẹrọrọ. Wọn ko mọ ohun kan ti n lọ labẹ oorun. Jobu 14:21. Isinmi alabukun fun olododo ti o ti rẹ! Akoko, boya o pẹ tabi o ya, dabi igba kekere si wọn. Wọn sun; kakaki Ọlọrun ni yoo ji wọn si aiku ologo. “Nitori ti kakaki yoo dun, a o si ji awọn oku dide ni aidibajẹ. . . . Nigba ti ara idibajẹ yii ba gbe aidibajẹ wọ, ti ara kiku yii ba gbe aiku wọ, nigba naa ni ohun ti a kọ silẹ yoo ṣẹ wipe, A gbe iku mi ni iṣẹgun.” 1 Kọrintin 15:52—54. Bi a ṣe n pe wọn jade kuro ninu orun wọn, wọn a bẹrẹ ironu wọn nibi ti wọn fi i silẹ si. Ohun ti wọn ni imọlara rẹ kẹyin ni irora iku; ero wọn ti o kẹyin ni wipe wọn n ṣubu si abẹ agbara ipo oku. Nigba ti wọn ba ji dide kuro ninu iboji, ero ayọ wọn akọkọ yoo jade pẹlu ọrọ iṣẹgun: “Iku, oró rẹ da? Isa oku, iṣẹgun rẹ da?” Ẹsẹ 55.

34

Ṣe Awọn Eniyan Wa Ti Wọn Ti Ku Le Ba Wa Sọrọ?

Iṣe iranṣẹ awọn angẹli mimọ, bi a ti fihan ninu Iwe Mimọ, jẹ otitọ ti o tuni ninu julọ, ti o si ṣe iyebiye si gbogbo awọn atẹle Kristi. Ṣugbọn ẹkọ ti o gbajugbaja ti ṣokunkun bo ikọni yii, ti o si tun yi pada. Ikọni wipe a bi aiku mọ eniyan, ti a kọkọ mu wa lati inu ironu awọn abọrisa, ninu okunkun ifasẹyin nla, ti a si mu wọ inu igbagbọ Kristẹni, ti ọpo otitọ ti a kọni kedere ninu Iwe Mimọ wipe "oku ko mọ ohun kan." Ọpọlọpọ ti gbagbọ wipe awọn ẹmi oku ni awọn "ẹmi ti n ṣe iṣẹ iranṣẹ, ti a ran jade lọ lati lọ ṣiṣẹ fun awọn ti yoo jẹ ajogun igbala." A si ṣe eyi laika ẹri Iwe Mimọ si nipa iwalaaye awọn angẹli ọrun, ati ibaṣepọ wọn pẹlu itan eniyan, ṣaaju ki eniyan kankan to ku.

Ikọni wipe eniyan wa laaye ninu iku, paapaa julọ igbagbọ wipe ẹmi awọn ti wọn ti ku le pada wa lati ṣiṣẹ fun awọn alaaye, ti pese ọna silẹ fun ibẹmilo ode oni. Bi a ba gba awọn oku siwaju Ọlọrun ati awọn angẹli mimọ, ti wọn si ni oye ti o pọ pupọ ju eyi ti wọn ni tẹlẹ lọ, ki lo de ti wọn ko pada wa sinu aye lati wa kọ awọn alaaye ki wọn si la wọn loye? Gẹgẹ bi awọn akẹkọ nipa Ọlọrun ode oni ṣe n kọni wipe, ẹmi awọn ti wọn ti ku n rababa lori awọn ọrẹ wọn laye, kilode ti ko fi yẹ ki a gba wọn laaye lati ba wọn sọrọ, lati kì wọn nilọ nipa ibi tabi tu wọn ninu ninu ibanujẹ wọn? Bawo ni awọn ti wọn gbagbọ ninu iwalaaye eniyan ninu iku ṣe le kọ ohun ti o wa si ọdọ wọn gẹgẹ bi imọlẹ ọrun lati ọdọ awọn ẹmi ti a ṣe logo silẹ? Wọn ka ọna yii si ọna mimọ, nipasẹ rẹ ni Satani si n gba mu erongba rẹ ṣe. Awọn angẹli ti wọn ti ṣubu ti wọn n ṣe ifẹ rẹ n fi ara han gẹgẹ bi iranṣẹ lati inu aye ẹmi. Nigba ti wọn n wipe wọn n mu alaaye wa

sinu iṣẹ iranṣẹ awọn oku, ọmọ alade okunkun n lo agbara buburu rẹ lori iye wọn.

O ni agbara lati mu irisi ọrẹ ẹni ti o ti ku wa siwaju eniyan. Ayederu naa peye; wọn ri irisi, ọrọ ati ohùn, gẹgẹ bi ojulowo pẹlu iyalẹnu. Ọpọlọpọ ni wọn ri itunu pẹlu idaniloju wipe awọn ololufẹ wọn n jẹgbadun alaafia ni ọrun, laini ifura ewu, wọn fi eti silẹ "si awọn ẹmi atanniiẹ, ati ikọni eṣu."

Nigba ti a mu ki wọn gbagbọ wipe awọn oku maa n pada wa lati ba wọn sọrọ lootọ, Satani mu ki awọn ti wọn ti ku laimura silẹ o jade wa. Wọn a sọ wipe inu wọn dun ni ọrun ani pe wọn wa ni ipo ọla nibẹ, bayi ni a ṣe n kọni ni aṣiṣe yii kaakiri wipe ko si iyatọ laarin olododo ati ẹni buburu. Awọn ti n dibọn bi olubẹwo lati aye ẹmi nigba miran maa n sọ akiyesi ati ikilọ ti wọn maa n jẹ otitọ. Bi wọn ba ti n fi ọkan tan wọn, wọn a mu awọn ikọni ti wọn tako igbagbọ ninu Iwe Mimọ ni ọna ti o han kedere wa. Pẹlu ifarahan wipe wọn ni ifẹ ti o jinlẹ ninu alaafia awọn ọrẹ wọn ninu aye, wọn a mu awọn aṣiṣe to lewu julọ wa. Nitori pe wọn n sọ awọn otitọ diẹ, ati pe nigba miran wọn maa n sọ asọtẹlẹ ọjọ iwaju, eyi jẹ ki o dabi ẹnipe ọrọ wọn ṣe e gbẹkẹle; ọpọlọpọ eniyan a si yara kankan gba ẹkọ eke wọn, wọn a ni igbagbọ patapata ninu wọn, a fi bi ẹnipe wọn jẹ otitọ ti o mọ julọ ninu Bibeli. A kọ ofin Ọlọrun silẹ, a kẹgan Ẹmi oore ọfẹ, wọn si ri ẹjẹ maṣemu bi ohun aimọ. Awọn ẹmi sọ wipe Kristi ki i ṣe Ọlọrun, ani wọn gbe Ẹlẹda si ipele kan naa pẹlu ara wọn. Bayii labẹ aabo ohun miran, ọlọtẹ nla naa si n tẹsiwaju ninu ijakadi rẹ pẹlu Ọlọrun, ti o bẹrẹ ni ọrun, ti o si tẹsiwaju ninu rẹ lori ilẹ aye fun bi ẹgbẹrun ọdun mẹfa.

Ọpọlọpọ ni wọn ri ifarahan ẹmi bii mọkaruuru ati itanjẹ lati ọdọ awọn ti n ba ẹmi lo. Ṣugbọn nigba ti o jẹ ootọ wipe a ti fun awọn eniyan ni ẹtan gẹgẹ bi ifarahan nitootọ, sibẹ a si ri ifihan agbara ẹmi ni ọna ti o lagbara. Ikanlẹkun kokooko eyi ti o bẹrẹ ibẹmilo ti ode oni ki i ṣe ẹtan tabi arekereke, ṣugbọn iṣẹ taara awọn angẹli buburu ni, ti wọn fi ọkan ninu awọn eke ti o ṣe aṣeyọri julọ lati pa ọkan run han. Ọpọ ni a o tanjẹ pẹlu igbagbọ wipe itanjẹ lasan ni ibẹmilo; nigba ti wọn ba ri ifarahan lojukoju ti wọn ko le ṣe ju ki wọn gba wipe o kọja agbara eniyan lọ, a o tan wọn jẹ, wọn a gba wọn gẹgẹ bi agbara nla Ọlọrun.

Awọn eniyan wọnyi fi oju fo ẹri Iwe Mimọ nipa awọn iṣẹ iyanu ti Satani ati awọn aṣoju rẹ n ṣe kọja. Nipasẹ agbara Satani ni awọn pidanpidan Farao fi le ṣe ayederu iṣẹ Ọlọrun. Pọlu jẹri si wipe ṣaaju wiwa Kristi lẹẹkeji, iru ifarahan agbara Satani bẹẹ yoo wa. "Iṣiṣẹ Satani pẹlu gbogbo agbara ati ami ati iṣẹ iyanu eke, ati pẹlu gbogbo itanjẹ aiṣododo," yoo wa ṣaaju wiwa Oluwa. 2 Tẹsalonika 2:9, 10.

Apostoli Johanu, ni ṣiṣe alaye agbara ti n ṣe iṣẹ iyanu naa sọ wipe yoo fi ara han ni ọjọ ikẹyin, o sọ wipe: “O n ṣe iṣẹ iyanu nla debi pe o mu ina sọkalẹ lati ọrun wa si ori ilẹ aye ni oju gbogbo eniyan, o si tan awọn ti n gbe ori ilẹ aye jẹ nipasẹ awọn iṣẹ iyanu wọnni ti o ni agbara lati ṣe.” Ifihan 13:13, 14. Ki i ṣe wipe a n dibọn ni a n sọ nibi. A tan awọn eniyan jẹ nipasẹ awọn iṣẹ iyanu ti awọn aṣoju Satani ni agbara lati ṣe, ki i ṣe wipe ti o dabi ẹnipe wọn ṣe.

Ọmọ alade okunkun, ti o ti n fi igba pipẹ lo agbara nla rẹ lati ṣiṣẹ itanjẹ, n fi ọgbọn mu ki idanwo rẹ o ba gbogbo eniyan mu ninu ipo ati ẹgbẹ ti wọn wa. Si awọn ọlaju, o fi ibẹmilo han ni ọna mimọ ati oye, nipa eyi a fa ọpọlọpọ sinu idẹkun rẹ. Ọgbọn ti ibẹmilo n funni ni apostoli Jakọbu ṣe alaye bi eyi ti “ko ti oke wa, ṣugbọn ti aye ni, ti ara ni, ti ẹmi eṣu si ni pẹlu.” Jakọbu 3:15. Eyi pẹlu ni atanniijẹ nla naa dọwọbo, bi didọwọ bo o yoo ba ṣiṣẹ fun daradara. Ẹni ti o le fi ara han pẹlu didan serafu ọrun niwaju Kristi nigba idanwo ninu aginju, n wa si ọdọ eniyan ni ọna ti o fanimora julọ bi angẹli imọlẹ. A ṣipẹ si ironu wa nipa sisọ ohun ti o niyi; o n mu inu awọn alafẹfẹyẹyẹ dun pẹlu awọn ohun ti n fi ayọ kun ni; o n wa ifẹ eniyan nipa fifi ifẹ ati iṣeun rere han ni ọna ti o yọ lẹnu. A ru ironu eniyan ga soke, ni didari eniyan lati ni igberaga ninu ọgbọn ara wọn ki wọn baa le gan Ẹni Ayeraye ninu ọkan wọn. Alagbara nì ti o le gbe Olurapada aye lọ si ori oke giga ti o si mu ki gbogbo ijọba aye ati ogo wọn o kọja niwaju Rẹ, yoo mu idanwo wa si ọdọ eniyan ni ọna ti yoo yi ero awọn ti agbara Ọlọrun ko daabobo pada.

Satani n tan eniyan jẹ ni akoko yii gẹgẹ bi o ti ṣe tan Efa jẹ ni Edẹni nipa iyin eke, nipa riru ifẹ lati ni imọ ti a ko faaye gba soke, nipa riru ifẹ fun igbera ẹniga soke. Ifẹ awọn iwa buburu wọnyi ni o fa iṣubu rẹ, nipasẹ wọn o lero lati pa eniyan run. “Ẹyin yoo dabi Ọlọrun” ni o wi, “ni mimọ rere ati buburu.” Jẹnẹsisi 3:5. Ibẹmilo n kọni wipe “eniyan jẹ ẹda ti n dagbasoke; wipe ayanmọ rẹ ni, lati igba ti a ti bi, lati maa dagba titi aye ainipẹkun, lati di Ọlọrun.” Siwaju si: eniyan ni yoo ṣe idajọ ara rẹ, kii si i ṣe ẹlomiran.” “Idajọ naa yoo jẹ rere, nitori pe idajọ ara ẹni ni. . . . Ìtẹ naa wa ninu rẹ.” Olukọ ibẹmilo kan sọ, bi “imọlara ẹmi” ṣe n dide ninu rẹ wipe: “Ẹyin ara mi, gbogbo eniyan jẹ ẹni ti o ku diẹ ki o di ọlọrun.”

Bayi, dipo ododo ati iwa pipe Ọlọrun ailopin, ohun ti o yẹ ki a bu ọla fun ni tootọ; dipo ododo pipe ofin Rẹ, odiwọn tootọ fun idagbasoke eniyan, Satani mu iwa eniyan funra rẹ, ti o kun fun ẹṣẹ ti o si baku gẹgẹ bi ohun kan ṣoṣo ti o yẹ ki a bu ọla fun, odiwọn kan ṣoṣo fun idajọ, tabi odiwọn iwa. Itẹsiwaju yii ki i ṣe lọ si oke bikoṣe lọ si isalẹ.

O jẹ ofin ti oye ati ti ẹmi wipe nipa wiwo a n yipada. Oye maa n mu ara rẹ dọgba pẹlu ohun ti o ba n ronu le lori. O maa n dabi ohun ti a

ba fẹran ti a si bọwọ fun. Eniyan ko le ga ju odiwọn iwa mimọ tabi iṣẹ rere tabi otitọ rẹ lọ. Bi o ba jẹ wipe ara rẹ ni odiwọn ti o ga julọ, ko le ri ohun ti o ga ju eyi lọ. Dipo bẹẹ, a maa tẹri sodo siwaju ati siwaju si ni. Oore ọfẹ Ọlọrun nikan ni o le gbe eniyan soke. Bi a ba fi eniyan silẹ fun ara rẹ, iwa rẹ a maa lọ sodo ni laisi idaduro.

Si awọn ti wọn n tẹ ara wọn lọrun, olufẹ faaji, olufẹ ara, ibẹmilo n fi ara rẹ han labẹ iboju ti ko lagbara to ti awọn ọlaju ati amoye; ninu abala rẹ ti o buru si wọn ri ohun ti o ba ohun ti ọkan wọn fa si mu. Satani n wa gbogbo ohun ti o jọ ibaku ninu iṣẹda eniyan, o sami si awọn ẹṣẹ ti olukuluku n fẹ lati da, a wa ri wipe anfani wa lati tẹ ifẹ lati wuwa buburu lọrun. O n dan eniyan wo lati ṣe aṣeju ninu ohun ti o dara funra rẹ, nipasẹ ainiwọntuwọnsi, a mu ki wọn ko aarẹ ba agbara ti ara, ti ọpọlọ ati ti iwuwasi. O ti pa ọpọlọpọ, o si n pa ọpọlọpọ run nipasẹ titẹ ifẹ ara lọrun, nipa eyi, a sọ gbogbo iṣẹda eniyan da ti ẹranko. Lati pari iṣẹ rẹ, o sọ nipasẹ awọn ẹmi wipe "ọgbọn tootọ gbe eniyan ga ju ofin lọ;" wipe "ohunkohun ti a ba ri ni o tọna;" wipe "Ọlọrun ki i bani wi;" ati pe "gbogbo ẹṣẹ ti a ba da ko lẹbi." Nigba ti a ba mu ki eniyan o gbagbọ wipe ifẹ ọkan ni ofin ti o ga julọ, wipe ominira ni aini akoso, ati pe ara rẹ ni eniyan yoo jiyin fun, tani o wa le yalẹnu wipe iwa ibajẹ ati iwa buburu tan kalẹ nibi gbogbo? Ọpọ ni wọn n yara kankan gba awọn ikọni ti yoo fi wọn silẹ lati ṣe igbọran si aṣẹ ọkan aimọ wọn. Wọn gbe akoso iṣera-ẹni si ori ifẹkufẹ ara, wọn mu ki agbara oye ati ọkan o tẹriba fun itẹsi ẹranko ti inu eniyan, Satani si n fi ayọ n gbá ọpọlọpọ ti wọn pe ara wọn ni atẹle Kristi sinu ẹwọn rẹ.

Ṣugbọn a ko nilo lati tan ẹnikẹni jẹ nipa awọn eke tí ibẹmilo n sọ sita. Ọlọrun ti fun araye ni imọlẹ ti o to lati jẹ ki wọn ri idẹkun naa. Gẹgẹ bi a ti fihan seyin ero ti o jẹ ipilẹ fun ibẹmilo n woya ija pẹlu ọrọ ti o han kedere ninu Iwe Mimọ. Bibeli sọ wipe oku ko mọ ohun kan, wipe ero wọn ti pari, wọn ko ni ipin ninu ohunkohun ti a n ṣe labẹ oorun, wọn ko mọ ohun kan nipa ayọ ati ibanujẹ awọn ti wọn jẹ ololufẹ wọn julọ ninu aye.

Siwaju si, Ọlọrun ti fi ofin de gbogbo ohun ti o ba jọ mọ biba ẹmi ẹni ti o ti ku sọrọ. Ni akoko awọn Heberu awọn kan wa ti wọn n sọ, bi awọn abẹmilo ti n sọ loni, wipe wọn le ba oku sọrọ. Ṣugbọn "ẹmi oku" bi a ti n pe awọn olubẹwo lati aye miran yii, ni Bibeli pe ni "ẹmi eṣu." (Ẹ wo Numeri 25:1—3; O. Dafidi 106:28; 1 Kọrintin 10:20; Ifihan 16:14.) Iṣẹ biba ẹmi awọn oku sọrọ ni Oluwa pe ni ohun irira, a ko si fi aaye gba a labẹ ijiya iku. Lefitiku 19:31; 20:27. Ni bayii a n fi oju ẹgan wo iṣẹ ajẹ. Wipe eniyan le ba ẹmi sọrọ ni a ri gẹgẹ bi itan asan ti igba oju dudu. Ṣugbọn ibẹmilo, eyi ti awọn atẹle rẹ pọ ni iye ti ri aaye wọ

aarin awọn ọmọwe, o ti wọ inu ijọ, o si n ri oju rere awọn aṣofin, ani ni aafin awọn ọba—olu awọn itanjẹ yii jẹ isọji iṣẹ ajẹ ti a tako ti a si fi ofin de, ṣugbọn ni ọna tuntun.

Bi ko ba si ẹri miran nipa ohun ti ibẹmilo jẹ gan an, o to fun Kristẹni lati mọ wipe ẹmi naa ko ṣe iyatọ laarin ododo ati ẹṣẹ, laarin awọn apostoli Kristi ti wọn ni iwa mimọ ti wọn si jẹ ẹni rere ati eyi ti o ni iwa ibajẹ julọ laarin awọn iranṣẹ Satani. Nipa fifi awọn oniwa ibajẹ han wipe wọn wa ni ọrun, wipe wọn wa ni ipo giga nibẹ, Satani n sọ fun araye wipe: "Ko si bi o ti wu ki o buru to; o baa gbagbọ tabi ki o ma gbagbọ ninu Ọlọrun ati Bibeli. Gbe bi o ti wu ọ; ọrun ni ile rẹ." Awọn olukọ onibẹmilo n sọ kedere wipe: "Gbogbo ẹni ti o ba ṣe ibi, rere ni niwaju Ọlọrun, O si ni inu didun si wọn; tabi, Nibo ni Ọlọrun idajọ gbe wa?"Malaki 2:17. Ọrọ Ọlọrun sọ wipe: "Egbe ni fun ẹni ti n pe ibi ni ire ati ire ni ibi; ti o n fi okunkun pe imọlẹ ati imọlẹ ni okunkun." Aisaya 5:20.

Awọn apostoli ti awọn emi eke yii gbe wọ ni a jẹ ki wọn o tako ohun ti wọn kọni ni abẹ aṣẹ Ẹmi Mimọ nigba ti wọn wa laaye. Wọn sẹ wipe Bibeli ti ọdọ Ọlọrun wa, nipa eyi wọn n fa ipilẹṣẹ ireti Kristẹni ya, wọn si n pa ina ti n fi ọna Ọlọrun han. Satani n mu ki awọn eniyan o gbagbọ wipe itan arosọ lasan ni Bibeli, tabi iwe ti o yẹ fun iran eniyan nigba ti koi ti i dagba, ṣugbọn bayi, a nilati fi oju tẹnbẹlu rẹ tabi ki a kọ ọ silẹ bi eyi ti ko ba igba mu. O wa n jẹ ki awọn ifarahan ẹmi o rọpo ọrọ Ọlọrun. Eyi jẹ ọna ti o wa ni abẹ iṣakoso rẹ nikan ṣoṣo, nipasẹ eyi, o le mu ki aye o gba ohun ti o ba fẹ gbọ. Iwe ti yoo da oun ati awọn atẹle rẹ lẹjọ ni o ṣu okunkun bo, nibẹ gan ni o fẹ ki o wa; o fi Olugbala aye han gẹgẹ bi eniyan lasan. Bi awọn ẹṣọ Romu ti wọn n ṣọ iboji Jesu ti tan iroyin irọ kalẹ eyi ti awọn alufa ati alagba fi si wọn lẹnu lati maṣe muni gbagbọ ninu ajinde Rẹ, bẹẹ gẹgẹ ni awọn ti wọn gbagbọ ninu ifarahan ẹmi ṣe n jẹ ki o han wipe ko si ohun ti o yanilẹnu ninu awọn iṣẹlẹ nipa igbesi aye Olugbala wa. Lẹyin ti wọn ti Jesu sẹyin, wọn wa n pe akiyesi si iṣẹ iyanu ara wọn, wipe awọn wọnyi ju awọn iṣẹ Kristi lọ lọna ti o ga.

Lootọ ni wipe ibẹmilo ti n yi irisi rẹ pada, ti o si n fi awọn ohun ti ko bojumu ninu rẹ pamọ, o n wa ni awọ Kristẹni. Ṣugbọn awọn ọrọ rẹ lati ori pẹpẹ, ati ile itẹwe ti wa niwaju awọn eniyan fun ọjọ pipẹ, ninu eyi ni a si ti fi iwa rẹ gan an han. A ko le fi awọn ikọni yii pamọ, bẹẹ ni a ko le sẹ wọn.

Ani ni ipo ti o wa yii, dipo ki o yẹ fun ifarada ju ti tẹlẹ lọ, o tilẹ tun wa buru si ni nitori ẹtan arekereke. Ni akọkọ, o kọ Kristi ati Bibeli silẹ, bayi o sọ pe oun gba awọn mejeeji. Ṣugbọn o tumọ Bibeli ni ọna ti o dunmọ ọkan ti a ko sọ dọtun ninu, nigba ti o n sọ awọn otitọ ọlọwọ

ti wọn ṣe pataki ninu rẹ di asan. A n sọ wipe ifẹ ni iwa Ọlọrun ti o tobi julọ, ṣugbọn a rẹ ẹ silẹ di ironu ọkan alailagbara, ti ko ṣe iyatọ laarin rere ati ibi. Ododo Ọlọrun, bi o ti ba ẹṣẹ wi, ati ohun ti ofin Rẹ beere fun ni a pamọ kuro niwaju awọn eniyan. A kọ awọn eniyan lati ri Ofin Mẹwa bi iwe ti o ti ku. Awọn itan arosọ ti wọn n dun mọni, ti wọn n rani níyè n muni nigbekun o si n dari eniyan lati kọ Bibeli silẹ gẹgẹ bi ipilẹṣẹ igbagbọ wọn. A ṣe Kristi bii ti akọkọ; ṣugbọn Satani ti fọ awọn eniyan loju ti wọn ko fi ri itanjẹ naa.

Awọn perete ni wọn ni oye ti o tọ nipa agbara itanjẹ ibẹmilo ati ewu ti o wa ninu bibọ si abẹ agbara rẹ. Ọpọlọpọ ni wọn n danwo lati le tẹ iwadi wọn lọrun lasan. Wọn ko ni igbagbọ tootọ ninu rẹ, ibẹru a si kun inu wọn bi wọn ba ni ero wipe wọn jọwọ ara wọn silẹ fun akoso ẹmi. Ṣugbọn wọn n wọ inu ibi ti a ka leewọ, apanirun nla naa a si lo agbara rẹ le wọn lori laiṣe wipe wọn fi ọwọ si. Ẹ jẹ ki a mu ki wọn fi iye wọn silẹ fun idari rẹ lẹẹkanṣoṣo, yoo si mu wọn ni igbekun. Ko ṣe e ṣe, ninu agbara ara wọn lati yọ kuro ninu agbara ifani ati iraniniye rẹ. Ayafi agbara Ọlọrun ti a fifunni ni idahun si adura igbagbọ atọkanwa, nikan ni o le tu awọn ọkan ti a de nigbekun silẹ.

Gbogbo awọn ti wọn n tẹsiwaju ninu iwa ẹṣẹ tabi ti wọn mọọmọ n da ẹṣẹ kan ti wọn mọ, n kọwe si idanwo Satani. Wọn ya ara wọn kuro ni ọdọ Ọlọrun ati kuro ni abẹ awọn angẹli Rẹ; bi eṣu ti n mu ẹtan rẹ wa, wọn wa lai ni aabo, wọn a si ṣubu bi ẹran ijẹ. Awọn ti wọn n fi ara wọn si abẹ agbara rẹ ko mọ daju ibi ti iwa wọn yoo yọri si. Nigba ti o ti gbe wọn ṣubu, adanniwo a lo wọn bi aṣoju rẹ lati tan awọn miran sinu iparun.

Woli Aisaya sọ wipe: “Nigba ti a ba sọ fun yin, Ẹ wa awọn ti n ba oku lo, ati awọn oṣo ti n ké, to si n kùn; ko ha yẹ ki orilẹ ede o wa Ọlọrun wọn ju ki awọn alaaye o maa wa awọn oku? Si ofin ati si ẹri: bi wọn ko ba sọ gẹgẹ bi ọrọ yii nitori ti ko si imọlẹ ninu wọn ni.” Aisaya 8:19, 20. Bi awọn eniyan ba nifẹ lati gba otitọ ti a sọ kedere ninu Iwe Mimọ nipa iṣẹda eniyan ati ipo awọn oku, wọn yoo ri ninu ọrọ ati ifarahan awọn abokusọrọ iṣọwọṣiṣẹ Satani pẹlu agbara ati ami ati iṣẹ iyanu eke. Ṣugbọn dipo ki wọn fi ominira ti o ba ọkan idibajẹ yii mu silẹ, ki wọn si kọ ẹṣẹ ti wọn fẹran silẹ, ọpọlọpọ di oju wọn si imọlẹ wọn si n rin lọ laika ikilọ si, nigba ti Satani n fi idẹkun rẹ yi wọn ka ti wọn si n di ẹran ijẹ rẹ. “Nitori ti wọn ko gba ifẹ fun otitọ, ki a baa le gba wọn la,” nitori naa “Ọlọrun ran itanjẹ ti o lagbara si wọn, ki wọn baa le gba eke gbọ.” 2 Tẹsalonika 2:10, 11.

Awọn ti wọn n tako ikọni ibẹmilo ko ba eniyan nikan ja, bikoṣe Satani ati awọn ẹmi buburu ni ibi giga. Satani ko ni kuro ayafi bi a ba ti i sẹyin pẹlu agbara awọn iranṣẹ ọrun. Awọn eniyan Ọlọrun nilati

koju rẹ, bi Olugbala wa ti ṣe, pẹlu awọn ọrọ: “A ti kọwe rẹ.” Satani le ka Iwe Mimọ sori ni akoko yii bi i ti akoko Kristi, yoo si ṣi awọn ikọni rẹ tumọ lati fi idi awọn itanjẹ rẹ mulẹ. Awọn ti yoo duro ni akoko ewu nilati ni oye ẹri Iwe Mimọ funra wọn.

Ọpọlọpọ ni awọn ẹmi eṣu yoo ko loju ti wọn yoo gbe awọn ara ile tabi ọrẹ wọn wọ ti wọn yoo si maa sọ ẹkọ odi ti o lewu julọ. Awọn olubẹwo yii yoo ṣipẹ si aanu ọkan wa ti o tutu julọ wọn yoo si ṣiṣẹ iyanu lati fi idi eke wọn mulẹ. A nilati mura silẹ lati doju kọ wọn pẹlu otitọ inu Bibeli wipe oku ko mọ ohun kankan ati wipe ẹmi eṣu ni awọn ti wọn n fi ara han yii.

“Akoko idanwo, ti yoo wa sori gbogbo aye, lati dan awọn ti n gbe ori ilẹ aye wo” (Ifihan 3:10) wa niwaju wa. A o tan gbogbo awọn ti igbagbọ wọn ko fi ẹsẹ mulẹ to ninu ọrọ Ọlọrun jẹ, a o si bori wọn. Satani “n ṣiṣẹ pẹlu gbogbo itanjẹ ni aiṣododo” lati ni akoso lori awọn ọmọ eniyan, awọn itanjẹ rẹ yoo si maa pọ si lojoojumọ. Ṣugbọn o le ṣe aṣeyọri niwọn bi awọn eniyan ba ti mọọmọ yọnda ara wọn fun awọn idanwo rẹ. Awọn ti wọn n fi tọkantọkan wa imọ otitọ ti wọn si n ṣe akitiyan lati fọ ọkan wọn mọ nipa igbọran, ti wọn n ṣe ohun ti wọn le ṣe lati pese ara wọn silẹ fun ijakadi naa yoo ri ninu otitọ ọrọ Ọlọrun, aabo tootọ. “Nitori ti iwọ pa ọrọ suuru Mi mọ, Emi yoo pa ọ mọ pẹlu” (ẹsẹ 10), ni ileri Olugbala. Yoo ran gbogbo angẹli kuro ni ọrun lati daabo bo awọn eniyan rẹ ju ki O fi ọkan kan ti o gbẹkẹle silẹ ki Satani o bori rẹ lọ. Woli Aisaya ṣe afihan itanjẹ ẹlẹru ti yoo wa si ori awọn eniyan buburu, ti yoo mu ki wọn o ro wipe wọn a ri aabo kuro lọwọ idajọ Ọlọrun: “A ti da majẹmu pẹlu iku, a si ti ba iboji mulẹ; nigba ti pasan gigun ba kọja, ki yoo de ọdọ wa: nitori awa ti fi eke ṣe aabo wa, ati labẹ irọ ni awa fi ara wa pamọ si.” Aisaya 28:15. Ninu ẹgbẹ ti a ṣe alaye rẹ nibi ni awọn ti wọn n tẹsiwaju ninu aigbọran wọn ṣugbọn ti wọn n tu ara wọn ninu pẹlu idaniloju wipe ko si ijiya fun ẹlẹṣẹ wa; wipe gbogbo eniyan laika bi wọn ti kun fun iwa ibajẹ to, ni a o gba si ọrun, lati di angẹli Ọlọrun. Ṣugbọn ni pataki julọ ni awọn ti wọn ba iku da majẹmu ti wọn si ba ipo oku mulẹ, ti wọn kọ otitọ eyi ti Ọrun fifunni gẹgẹ bi aabo fun olododo ni ọjọ iṣoro silẹ, ti wọn si gba aabo eke Satani rọpo—ẹtan ti ibẹmilo.

Ifọju awọn eniyan iran yii kọja afẹnusọ. Ọpọlọpọ ni wọn kọ ọrọ Ọlọrun silẹ gẹgẹ bi ohun ti ko yẹ ki a gbagbọ ti wọn si n yara kankan pẹlu igboya lati gba awọn itanjẹ Satani. Awọn alaigbagbọ ati apẹgan ba awọn ti wọn n jijadu fun igbagbọ awọn woli ati awọn apostoli wi gẹgẹ bi onitara alaimoye, wọn si n da ara wọn ninu dun nipa fifi awọn ọrọ Iwe Mimọ nipa Kristi ati eto igbala ati idajọ ti a o ṣe fun awọn ti wọn kọ otitọ silẹ ṣe ẹfẹ. Wọn ṣe ikaanu nla fun iye ti o kere,

ti ko lagbara ti o si n gba ohun asan gbọ ti o gba awọn ọrọ Ọlọrun ti o tun ṣiṣẹ igbọran si ofin rẹ. Wọn n fi idaniloju ti o lagbara han, afi bi ẹnipe, lootọ, wọn ti da majẹmu pẹlu iku, wọn si ti ba ipo oku mulẹ, afi bi ẹnipe wọn mọ idena ti ohunkohun ko le gbà kọja si aarin ara wọn ati igbẹsan Ọlọrun. Ko si ohun ti o le ru ibẹru wọn soke. Wọn ti fi ara wọn fun adanniwo patapata debi pe wọn wa ni ibaṣepọ timọtimọ pẹlu rẹ, wọn si kun fun ẹmi rẹ debi pe, wọn ko ni agbara ati ifẹ lati ja kuro ninu rẹ.

Fun igba pipẹ, Satani ti n mura silẹ fun akitiyan rẹ ti o kẹyin lati tan aye jẹ. A ṣe ipilẹ iṣẹ rẹ pẹlu idaniloju ti a fun Efa ni Edẹni: "Ẹyin ki yoo ku ikukiku kan." "Ni ọjọ ti ẹyin ba jẹ ninu rẹ, nigba naa ni oju yin yoo la, ẹyin yoo si dabi Ọlọrun, ni mimọ rere ati buburu." Jẹnẹsisi 3:4, 5. Diẹdiẹ ni o n pese ọna silẹ fun itanjẹ rẹ ti o ga julọ ninu idagbasoke ibẹmilo. Koi ti i pari ete rẹ; yoo pari rẹ ni akoko ikẹyin. Woli naa wi pe: "Mo ri awọn ẹmi aimọ mẹta bi ọpọlọ; . . . awọn ni ẹmi buburu ti n ṣiṣẹ iyanu, ti wọn jade lọ sọdọ awọn ọba aye ati ti gbogbo aye, lati gba wọn jọ si ogun ọjọ nla naa ti Ọlọrun alagbara." Ifihan 16:13, 14. Ayafi awọn ti a fi agbara Ọlọrun pamọ nipasẹ igbagbọ ninu ọrọ Rẹ, gbogbo aye ni a o gba jọ sinu itanjẹ yii. A n jẹ ki awọn eniyan o simi ninu aabo eke, itusilẹ ibinu Ọlọrun nikan ni yoo ta wọn ji.

Oluwa Ọlọrun sọ pe: "Idajọ ni Emi o fi le ẹṣẹ pẹlu, ati ododo le oṣuwọn, yinyin yoo gba aabo eke lọ, omi yoo si kun bo ibi isasi mọlẹ. Majẹmu yin ti ẹ ba iku da ni a o sọ di asan, ati imulẹ yin pẹlu iboji ki yoo duro; nigba ti pasan gigun yoo rekọja, nigba naa ni oun yoo tẹ yin mọlẹ." Aisaya 28:17, 18.

35

Igbogunti Ominira Ẹri Ọkan

Awọn Protestant ti n fi oju rere wo ẹsin Romu ni akoko yii ju ti awọn ọdun to kọja sẹyin lọ. Ni awọn orilẹ ede ti ẹsin Katoliki ko ti wọpọ, ti awọn atẹle popu n ṣiṣẹ ilaja lati le ni agbara, awọn eniyan si n tubọ ṣe alaibikita si nipa awọn ikọni ti wọn pin ijọ ti a fọ mọ niya kuro ninu ijọ padi; o n gbilẹ kan wipe, ṣe bí a ko yatọ to bẹẹ ju bẹẹ lọ bi a ti ro tẹlẹ, ati wipe bi a ba jọwọ awọn ohun diẹdiẹ silẹ, yoo jẹ ki a ni ibaṣepọ ti o dara si pẹlu Romu ni. Ni igba kan ri awọn Protestant ri ominira ẹri ọkan gẹgẹ bi ohun ti o niye lori ti a ra pẹlu ohun iyebiye. Wọn kọ awọn ọmọ wọn lati korira ẹsin popu ati lati gbagbọ wipe wiwa ni ibamu pẹlu Romu yoo tumọ si aiṣotitọ si Ọlọrun. Ṣugbọn ohun ti a n fihan lode oni ti yatọ to!

Awọn olugbeja ẹsin ijọ paadi n sọ wipe a n sọrọ buburu si ijọ, awọn ẹlẹsin Protestant si n gba bẹẹ. Ọpọ ni wọn n sọ wipe ko boju mu ki a maa wo ijọ ti ode oni pẹlu awọn iwa irira ati iwa aitọ ti wọn wọpọ ni akoko iṣejọba rẹ ni awọn igba aimọkan ati okunkun. Wọn dariji awọn iwa buburu rẹ gẹgẹ bi eyi ti o wa latari iwa aimoye ti o wa ni akoko naa, wọn si sọ wipe agbara ọlaju ti yi ero rẹ pada.

Ṣe awọn wọnyi ti gbagbe igbagbọ nipa aibaku ti agbara agberaga yii gbe kalẹ fun ẹgbẹsan (1800) ọdun sẹyin ni? Dipo ki wọn kọ ọ silẹ, wọn tun n tẹnumọ ni ọrundun kọkandinlogun pẹlu aiyi ohun pada ti o ju ti atẹyinwa lọ. Gẹgẹ bi Romu ti sọ wipe ijọ “ko ṣe aṣiṣe ri; bẹẹ ni ko ni ṣe aṣiṣe laelae; gẹgẹ bi Iwe Mimọ ti wi,” bawo ni yoo ṣe kọ awọn igbagbọ ti o ti n dari iṣesi rẹ latẹyinwa silẹ?

Ijọ padi ko ni fi igbagbọ nipa aibaku rẹ silẹ lae. Gbogbo ohun ti o ṣe ninu inunibini rẹ si awọn ti wọn kọ igbagbọ rẹ silẹ ni o ri gẹgẹ bi

eyi ti o dara; ṣe ko wa ni wu iru iwa kan naa, bi o ba ri anfani rẹ bi? Ẹ jẹ ki awọn idilọwọ ti awọn ijọba oṣelu la kalẹ o kuro, ki a si da Romu pada sinu agbara rẹ tẹlẹ, a o si ri isọji iwa ika ati inunibini rẹ pẹlu iyara kankan.

Onkọwe gbajugbaja kan sọ nipa iwuwasi ijọ padi nipa ominira ẹri ọkan, ati awọn ewu ti n pokuru mọ United States latari aṣeyọri ijọba rẹ bayii:

"Ọpọlọpọ wa ti wọn ni inu didun lati ri ibẹrukibẹru nipa ẹsin Roman Katoliki gẹgẹ bi agbaju ẹsin tabi iwa ọmọde. Awọn wọnyi ko ri ohunkohun ninu iwa ati iṣesi Romu ti o ṣodi si awọn agbekalẹ olominira wa, tabi ri ohunkohun ti o buru ninu idagbasoke rẹ. Ẹ jẹ ki a kọkọ fi ipilẹ iṣejọba wa wé titi ijọ Katoliki.

"Iwe iṣejọba United States fi aaye gba ominira ẹri ọkan. Ko si ohun ti o dara tabi ti o ṣe pataki ju u lọ. Popu Pius IX, ninu lẹta rẹ ti o kọ si awọn biṣọbu ni August 15, 1854, sọ pe: 'Ikọni eke ti ko boju mu tabi isọrọwere ti igbeja fun ominira ẹri ọkan jẹ aṣiṣe ti o niyọnu julọ—aarun ti o yẹ ki a bẹru ni ilu ju eyikeyi lọ.' Popu yii kan naa ninu lẹta rẹ ti December 8, 1864, fi 'gbogbo ẹni ti o ba beere fun ominira ẹri ọkan ati ifarada ẹsin' gegun pẹlu gbogbo awọn ti wọn n sọ wipe ijọ ko gbọdọ fi agbara muni.

"Ọrọ alaafia Romu ni United States ki i ṣe nitori iyipada ọkan. O maa n ni ifarada nibi ti ko ba ti ri iranlọwọ. Biṣọbu O' Connor sọ wipe: 'Ijọ Katoliki n fi ara da ominira ẹsin lasan ni titi ti yoo fi le ṣe idakeji rẹ lai ṣe e nijamba.' . . . Kadina ti St Louis sọ nigba kan wipe: "Ẹkọ odi ati aigbagbọ jẹ iwa ọdaran; ni awọn orilẹ ede Kristẹni, bii Itali ati Spain fun apẹẹrẹ, nibi ti gbogbo eniyan ti jẹ Katoliki, ati nibi ti ẹsin Katoliki ti jẹ eyi ti o ṣe pataki ninu ofin, a n jẹ wọn niya gẹgẹ bi iwa ọdaran yoku.' . . .

"Gbogbo kadina, biṣọbu agba, ati biṣọbu ninu ijọ Katoliki n jẹjẹ igbọran si popu, ninu eyi ti awọn ọrọ wọnyi wa: 'Ẹlẹko odi, oniyapa, ati oluṣọtẹ si oluwa wa (popu), tabi si awọn ti yoo wa ni ipo rẹ, ni maa tako ti maa si ṣe inunibini si pẹlu gbogbo ipa mi.'"

Otitọ ni wipe awọn Kristẹni tootọ wa ninu ijọ Roman Katoliki. Ọpọlọpọ ninu ijọ naa n sin Ọlọrun gẹgẹ bi imọlẹ ti wọn ni. A ko fun wọn ni aaye si ọrọ Rẹ, nitori idi eyi, wọn ko mọ otitọ. Wọn koi ti i ri iyatọ laarin iṣẹ ọkan alaaye ati aṣa ati isin lasan. Ọlọrun n fi ikaanu wo awọn ọkan wọnyi, ti wọn ni imọ ninu iru igbagbọ ti o jẹ ẹtan ti ko si le tẹnilọrun. Yoo jẹ ki itansan imọlẹ o wọ inu okunkun biribiri ti o yi wọn ka. Yoo fi otitọ han wọn, gẹgẹ bi o ti wa ninu Jesu, ti ọpọlọpọ yoo si wa si ọdọ awọn eniyan Rẹ.

Ṣugbọn ẹsin Romu gẹgẹ bi agbekalẹ ko si ni ibamu pẹlu iyinrere Kristi nisinsinyii gẹgẹ bi ko ti ṣe wa ni igba kankan latẹyinwa. Awọn ijọ

Protestant wa ninu okunkun nla tabi wọn i ba mọ awọn ami akoko. Ijọ Romu ti n jinlẹ ninu awọn agbekalẹ ati iṣọwọṣiṣẹ rẹ. Gbogbo ipa ni o n sa lati jẹ ki agbara rẹ o tankalẹ si ati ki ipa rẹ o pọ si ni imura silẹ fun ijakadi alagbara ti yoo ṣe pẹlu agidi lati gba akoso lori aye pada, lati pada fi idi inunibini rẹ mulẹ, ati lati mu gbogbo ohun ti ẹsin Protestant ti ṣe kuro. Ẹsin Katoliki n fi ẹsẹ mulẹ ni ibi gbogbo. Ẹ wo bi ijọ rẹ ati ile ijọsin rẹ ti n pọ si ni awọn orilẹ ede Protestant. Ẹ wo bi awọn ile ẹko ati ile ẹkọ ẹsin rẹ ti n lokiki ni ilẹ Amẹrika, ti awọn Protestant si n lọ sibẹ lati ibi gbogbo. Ẹ wo idagbasoke ilana ẹsin ni England ati iyapa loorekoore sinu ijọ Katoliki. Awọn nnkan wọnyi nilati ta ibẹru awọn ti ẹkọ iyinrere ailabawọn ṣe iyebiye loju wọn ji.

Protestant ti fi ọwọ ba ẹsin popu, o si ti ran an lọwọ; wọn ti pa ohun da, wọn si ti jọwọ ọpọ nnkan silẹ fun debi pe o ya wọn lẹnu lati ri bẹẹ ti ko si ye wọn. Awọn eniyan n di oju ara wọn si ohun ti ẹsin Romu jẹ gan an, ati ewu ti ijọba rẹ yoo mu wa. A nilati ta awọn eniyan ji lati koju ija si itẹsiwaju ọta ti o lewu fun ominira iṣelu ati ti ẹsin yii.

Ọpọlọpọ ni wọn ro wipe ẹsin Katoliki ko fanilojumọra ati wipe iṣọwọjọsin rẹ jẹ isin lemọlemọ ti o tutu ti ko si nitumọ. Nibi wọn ṣe aṣiṣe. Nigba ti ẹsin Romu duro lori itanjẹ, ki i ṣe ẹtan onipagunpagun ati alailọgbọn. Ijọsin Roman Katoliki jẹ eyi ti o lẹwa jọjọ. Afihan olowonla rẹ ati aṣa ọlọwọ rẹ n fa si iye eniyan ti yoo si pa ironu ati eri ọkan lẹnu mọ. O rániloju. Ile ijọsin nla, itolọwọọwọ, pẹpẹ oniwura, ibi ijọsin ti a ṣe lọṣọ, aworan ile ti o niye lori, ati awọn ere ti wọn lẹwa daradara lati ṣipẹ si ifẹ ẹwa. Etí ẹni a kun pẹlu. Orin ti ko lẹgbẹ. Awọn ohun elo orin to rinlẹ dodo, to dapọ mọ iro ọpọlọpọ ohùn bi o ti n goke lọ lara opó ilé ati àjà gíga awọn ile ijọsin nla rẹ, ko le ṣe ki o ma mu ọwọ ati iyin kun ọkan eniyan.

Ọla, iwuga ati ẹsin ti ode yii, ti o n fi ònfà ọkan ti o kun fun ẹṣẹ ṣe ẹlẹya lasan jẹ ẹri fun ibajẹ inu. Ẹsin Kristi ko nilo iru ẹwa bayii lati ṣe afihan rẹ. Ninu imọlẹ ti n tan lati ara agbelebu, ẹsin Kristẹni tootọ n fi ara han ni ọna ti o mọ ti o si rẹwa ti ko nilo ẹṣọ ode ara lati buyi fun. Ẹwa iwa mimọ, ẹmi irẹlẹ ti n dakẹ jẹẹ ni o niye lori niwaju Ọlọrun.

Iṣesi daradara ki i ṣe ohun ti a fi le mọ ero giga ati eyi ti o mọ́. Nini oye giga nipa iṣẹ ọnà, nini ifẹ si ohun ti o dara julọ, saba maa n waye ninu ọkan ẹni ti o kun fun ohun ti ara ati ti aye. Satani saba maa n lo wọn lati mu ki eniyan o gbagbe ohun ti o ṣe pataki julọ fun ọkan, lati gbagbe nipa ọjọ iwaju, iye ainipẹkun, lati yi wọn pada kuro ni ọdọ Oluranlọwọ ayeraye wọn, ati lati mu ki wọn o gbe fun aye yii nikan.

Ẹsin ti ode ara a maa wu awọn ti a koi ti i sọ ọkan wọn di ọtun. Igbega ati iṣọwọṣesin Katoliki ni agbara ti o n tannijẹ ti o si n rániniye; wọn a wa maa wo Ijọ Romu gẹgẹ bi oju ọna lọ si ọrun. Ko si ẹni naa

bikoṣe awọn ti wọn fi ẹṣẹ wọn mulẹ gbọin si ori ipilẹṣẹ otitọ, ti Ẹmi Ọlọrun si ti sọ ọkan wọn di ọtun nikan ni ipa rẹ ko le mu. Ọpọlọpọ ti ko ni iriri imọ Kristi yoo gba afarawe iwabiọlọrun laini agbara. Iru ẹsin bayi ni ọpọ ero n fẹ.

Bi ijọ ti sọ wipe oun ni ẹtọ lati dari ẹṣẹ ji jẹ ki awọn atẹle Romu o ni ominira lati dẹṣẹ, ati ilana ijẹwọ, eyi ti ko si idariji laisi rẹ, saba maa n fun eniyan ni ominira lati wuwa ibi. Ẹnikẹni ti o ba kunlẹ niwaju eniyan ti o bàkù, ti o si n sọ awọn ero ikọọkọ ati ironu ọkan rẹ ninu ijẹwọ ẹṣẹ, n ba ohun ti o fi n jẹ eniyan jẹ o si n rẹ gbogbo ohun ti o dara ninu ọkan rẹ silẹ. Ni jijẹwọ awọn ẹṣẹ ara rẹ si alufa—ẹlẹran ara, ẹlẹṣẹ ti o baku, ti o ti dibajẹ nipasẹ ọti ati iwakuwa,—odiwọn iwa rẹ ti wa silẹ, oun naa si di aimọ nipasẹ eyi. Ero rẹ nipa Ọlọrun ti dibajẹ bi irisi iran eniyan ti o ti ṣubu—nitori alufa duro gẹgẹ bi aṣoju Ọlọrun. Ijẹwọ abanijẹ laarin eniyan si eniyan yii jẹ orisun ikọọkọ nibi ti ọpọlọpọ iwa buburu tí n ko aimọ ba aye ti o si n pese rẹ silẹ fun iparun ikẹyin ti n sun jade wa. Sibẹ fun ẹni ti o fẹran itẹra-ẹni-lọrun, o rọrun lati jẹwọ ẹṣẹ fun eniyan bii ti ara rẹ ju ki o ṣipaya ọkan rẹ si Ọlọrun lọ. O rọrun fun iṣẹda eniyan lati ṣe iṣẹ ironupiwada ju lati kọ ẹṣẹ rẹ silẹ lọ; o rọrun lati jẹ ara ẹni niya pẹlu aṣọ ọfọ, ati ẹgun ọgan, ati ẹwọn wuwo ju ki o kan ifẹkufẹ ara mọ agbelebu lọ. Ọkan ti ko yipada ṣetan lati gbe ẹru wuwo ju lati tẹriba fun ajaga Kristi lọ.

Ijọ Romu ati ijọ Ju ni akoko ti Kristi kọkọ wá ni awọn ohun kan papọ ti wọn jọra wọn ni ọna ti o yanilẹnu. Nigba ti awọn Ju n tẹ gbogbo ipilẹ ofin Ọlọrun loju ni ikọkọ, niti ode ara, wọn n fi gbogbo agbara n pa akọsilẹ rẹ mọ, wọn n di ẹru wuwo le lori pẹlu ofin ati aṣa ti o mu ki igbọran o nira ti o si dabi ẹru wuwo. Bi awọn Ju ti sọ wipe wọn bọwọ fun ofin, bẹẹ gẹgẹ ni awọn atẹle Romu sọ wipe wọn bọwọ fun agbelebu. Wọn gbe ami ijiya Kristi ga nigba ti wọn sẹ Ẹni ti o duro fun ninu aye wọn.

Awọn ọmọ ijọ padi gbe agbelebu si ori awọn ile ijọsin wọn, si ori pẹpẹ wọn ati si ara aṣọ wọn. Ni ibi gbogbo ni a ti n ri ami agbelebu. Ni ibi gbogbo ni a ti n bọwọ fun ti a si n gbega ni ode ara. Ṣugbọn a tẹ awọn ikọni Kristi rì si abẹ awọn aṣa ti ko nitumọ, itumọ eke, ati ojuṣe ti o rorò. Ọrọ Olugbala nipa awọn Ju onitara alaimoye naa ba awọn adari ijọ Roman Katoliki mu ni ọna ti o nipọn si: “Nitori wọn a di ẹru wuwo ti o ṣòro lati ru, wọn a si gbe e ka awọn eniyan lejika; ṣugbọn awọn tikara wọn ko jẹ fi ika wọn kan ẹru naa.” Matiu 23:4. Awọn ọkan tootọ n wa ninu ibẹru nigba gbogbo wọn n bẹru ibinu Ọlọrun ti a dẹṣẹ si, nigba ti ọpọ awọn ijoye ijọ n gbe ninu ọrọ ati faaji ifẹ ara.

Ijọsin awọn ère ati ohun iranti, gbigbadura ni orukọ awọn eniyan mimọ ati gbigbe popu ga jẹ ète Satani lati yi ọkan awọn eniyan kuro

ni ọdọ Ọlọrun ati kuro ni ọdọ Ọmọ Rẹ. Lati ṣiṣẹ iparun wọn, o ṣa ipa lati yi akiyesi wọn kuro ni ọdọ Rẹ, nipasẹ ẹnikan ṣoṣo ti wọn fi le ri igbala. Yoo dari wọn si ohunkohun ti o ba le rọpo Ẹni ti O sọ pe: "Ẹ wa si ọdọ Mi, gbogbo ẹyin ti n ṣiṣẹ, ti a si di ẹru wuwo le lori, Emi yoo si fi isinmi fun yin." Matiu 11:28.

Iṣẹ Satani nigba gbogbo ni lati fi iwa Ọlọrun, ohun ti ẹṣẹ jẹ, ati awọn koko ọrọ ti wọn ṣe pataki ninu ijakadi nla naa han ni ona ti ko tọ. Ọgbọn ẹwẹ rẹ jẹ ki eniyan o ri ojuṣe rẹ si ofin Ọlọrun gẹgẹ bi eyi ti ko nitumọ, eyi si fun eniyan ni ominira lati dẹṣẹ. Ni akoko kan naa o jẹ ki wọn fẹran lati ni oye nipa Ọlọrun ni ọna ti ko tọ ki wọn baa le ri pẹlu ibẹru ati ikorira dipo ki wọn ri pẹlu ifẹ. Iwa ika ti o wa ninu rẹ ni o fihan wipe o jẹ ti Ẹlẹda; a gbe e wọ ilana ẹsin a si n fihan ninu ilana ijọsin. A fọ awọn eniyan níyè, Satani si n lo wọn gẹgẹ bi aṣoju rẹ lati ba Ọlọrun jagun. Nipa mimu ki a ri iwa Ọlọrun ni ọna ti ko tọ, awọn orilẹ ede abọrisa wa gbagbọ wipe wọn nilo lati fi eniyan rubọ lati le ri oju rere Ọlọrun; a si n wu iwa ika ti o buru julọ labẹ ẹsin ibọrisa ni gbogbo abala rẹ.

Ijọ Roman Katoliki, so aṣa ibọrisa mọ ẹsin Kristẹni, ati bi ẹsin ibọrisa, a fi iwa Ọlọrun han ni ọna ti ko tọ, o si n ṣe awọn ohun ti wọn roro ti wọn si n ṣini lara bii ti rẹ. Ni awọn ọjọ agbara Romu a ni awọn ohun elo ijẹniniya lati fipa muni lati gba awọn ikọni rẹ gbọ. Igi idanasunni wa fun awọn ti ko ni igbagbọ ninu ikọni rẹ. Ipaniyan nipakupa wa ni ọna ti a mọ̀ mọ titi ti a o fi ṣe afihan rẹ ni idajọ. Awọn oloye ijọ kẹkọ labẹ Satani oluwa wọn lati wa ọna lati fiyajẹni ni ọna ti o ga julọ ti ẹni ti a n fiya jẹ ko si ni ku. Ni ọpọlọpọ igba a n tu ifiyajẹni yii ṣe debi ti eniyan ko ni le farada a mọ, titi ti ẹni naa a fi juwọ silẹ, ti ẹni ti a n fiyajẹ a fi ri iku gẹgẹ bi idasilẹ didun.

Eyi ni atubọtan awọn ti wọn jẹ alatako Romu. Fun awọn atẹle rẹ, o ni ibawi pẹlu pasan, ebi kikankikan, ati jijẹ ara niya nigbogbo ọna ti a ba le gba ronu rẹ, ni ọna ti o n bani lọkan jẹ. Lati ri oju rere Ọrun, onironupiwada a ru ofin Oluwa nipa riru ofin ilera. A kọ wọn lati ja ide eyi ti O dá lati bukun ati lati mu inu eniyan dun ninu irin ajo aye rẹ. Agbala ile ijọsin kun fun ọpọ eniyan ti wọn lo igbesi aye wọn ninu akitiyan asan lati tẹ ifẹ ara ti a da mọ wọn ri, lati tẹ gbogbo ero ati imọlara ikaanu fun awọn ẹda ẹlẹgbẹ wọn ri gẹgẹ bi eyi ti o n bi Ọlọrun ninu.

Bi a ba fẹ lati ni oye iwa onroro Satani, ti o ti n fi ara han fun ọpọ ọdun, ki i ṣe laarin awọn ti wọn ko gbọ nipa Ọlọrun, ṣugbọn ni aaringungun ati ni gbogbo ibi ti ipa Kristẹni de, ohun ti a nilati ṣe lasan ni ki a wo itan ẹsin Romu. Nipasẹ ilana nla fun itanjẹ yii, ọmọ alade okunkun mu erongba rẹ lati ko ẹgan ba Ọlọrun ati ijiya ba

eniyan ṣẹ. Bi a si ti n ri bi o ti n ṣe aṣeyege ni fifi ara rẹ pamọ ti o si n ṣe iṣẹ rẹ nipasẹ awọn adari ijọ, o yẹ ki a ni oye si nipa idi ti o fi ni ikorira ti o pọ bẹẹ si Bibeli. Bi a ba ka Iwe Mimo, ifẹ ati aanu Ọlọrun yoo farahan, a o ri wipe ko gbe ọkan ninu awọn ẹru wuwo wọnyi ru ni. Gbogbo ohun ti O n beere fun ni ọkan onirobinujẹ ti n ṣe ikaanu, ẹmi irẹlẹ ti n ṣe igbọran.

Kristi ko funni ni apẹẹrẹ ninu igbesi aye Rẹ lati de ara ẹni mọ inu ile ijọsin lati le yẹ fun ọrun. Ko kọni wipe ki a tẹ ero ifẹ ati ikaanu ri. Ọkan Olugbala kun fun ifẹ. Bi eniyan ba ti n jẹ pipe ni iwa si, bẹẹ ni akiyesi rẹ a ṣe lagbara si, bẹẹ ni yoo ni oye ẹṣẹ si, bẹẹ si ni ikaanu rẹ fun awọn ti a n fiya jẹ a jinlẹ si. Popu sọ wipe oun ni arọpo Kristi, ṣugbọn bawo ni iwa rẹ ṣe jọ ti Olugbala wa to? Ṣe a ri ki Kristi o ti awọn eniyan mọ ọgba ẹwọn tabi igi ifiyajẹni nitori pe wọn ko jọsin Rẹ gẹgẹ bi Ọba ọrun? Njẹ a gbọ ki o ṣe idajọ iku fun awọn ti ko gba A? Nigba ti awọn eniyan abule Samaria kan fi oju tinrin Rẹ, inu bi apostoli Johanu, o si beere: "Oluwa iwọ ko ha fẹ ki a pe ina sọkalẹ lati ọrun, ki o si jo wọn run, ani bi Elija ti ṣe?" Jesu wo ọmọ ẹyin Rẹ pẹlu ikaanu, O si ba ẹmi lile inu rẹ wi, ni wiwipe: "Ọmọ eniyan ko wa lati pa ẹmi awọn eniyan run, bikoṣe lati gba a la." Luku 9: 54, 56. Ẹmi ti Kristi fihan ti yatọ si ẹmi ẹni ti o pe ara rẹ ni arọpo Rẹ to.

Bayi ijọ Romu n fi oju rere han si araye, o n tọrọ idariji fun awọn iwa ika onroro ti wọn wa ninu akọsilẹ rẹ. O ti wọ ara rẹ ni aṣọ bi Kristi, ṣugbọn ko yipada. Gbogbo ikọni ijọ padi ti wọn wa tẹlẹ ni wọn si wa loni. Wọn si gba awọn ikọni ti a ṣe nigba ti oju dudu gbọ. Ki ẹnikẹni maṣe tan ara rẹ jẹ. Ijọ padi ti awọn Protestant ṣetan bayi lati buyi fun sì ni eyi ti o ṣe akoso aye ni awọn ọjọ iṣẹ Atunṣe, nigba ti awọn eniyan Ọlọrun dide, laika ẹmi wọn si, ti wọn si n fi awọn aiṣedeede rẹ han. O si ni irera ati igberaga ti o n mu ki o lo agbara lori awọn ọba ati ijoye, o si n sọ wipe oun ni aṣẹ lati ọdọ Ọlọrun. Ẹmi ika ati onroro rẹ ko dinku nisinsinyii ju ti igba ti o pa ominira eniyan run ti o si pa awọn ẹni mimọ Ẹni Giga julọ.

Ijọ padi si jẹ ohun ti isọtẹlẹ sọ wipe yoo jẹ, iyapa ti igba ikẹyin. 2 Tẹsalonika 2:3, 4. O jẹ ara iṣesi rẹ lati wu iwa ti yoo jẹ ki o ri ohun ti o ba fẹ julọ, ṣugbọn labẹ ifarahan alayipada alagẹmọ, o fi oró ejo ti ko yipada pamọ. "Ko yẹ ki a pa igbagbọ mọ pẹlu ẹlẹkọ odi, tabi ẹnikẹni ti a ba funra si wipe o le ni ẹkọ odi," ni o wi. Ṣe agbara yii, eyi ti a ṣe akọsilẹ rẹ fun ẹgbẹrun ọdun pẹlu ẹjẹ awọn eniyan mimọ ni a o wa gba nisinsinyii gẹgẹ bi ara ijọ Kristi?

O ni idi ti awọn orilẹ ede Protestant fi n sọ wipe ẹsin Katoliki ko yatọ pupọ si ẹsin Protestant ju ti atẹyinwa lọ. Iyatọ wa nitootọ, ṣugbọn ki i ṣe ninu ijọ padi. Ẹsin katoliki jọ ẹsin Protestant ode oni

yii nitootọ, nitori ẹsin Protestant ti baję pupọpupọ lati akoko awọn Alatunṣe wa.

Bi awọn ijọ Protestant ti n wa oju rere aye, ifę eke ti fọ wọn loju. Wọn ko ri ju wipe o tọna lati gbagbọ ninu inurere inu gbogbo iwa buburu lọ, ni opin rẹ, laisi idaduro wọn a gbagbọ ninu iwa ibi ti o wa ninu gbogbo iwa rere. Dipo ki wọn duro lati gbeja igbagbọ ti a fun awọn eniyan mimọ lẹẹkan ṣoṣo, bayi, wọn n tọrọ aforiji lọwọ Romu fun ero ti ko dara ti wọn ni nipa rẹ, wọn n bẹbẹ fun idariji fun igbagbọ aimọkan wọn.

Ọpọ eniyan, ani awọn ti wọn ko fi oju rere wo ẹsin Romu ni ko ri ewu ti o pọ ninu agbara ati ipa rẹ. Ọpọ ni wọn n sọ wipe okunkun ninu ironu ati iwuwasi ti o wọpọ nigba Middle Ages ni o gba awọn ikọni, eke ati ifiyajẹni rẹ laaye lati tan kalẹ, ati pe bi oye akoko ọlaju wa yii ti pọ to, bi imọ ti n tan kalẹ to, ti awọn eniyan si ti n lawọ si nipa ẹsin ko ni gba ki ainifarada ati iwa onroro rẹ o sọji. A n fi ero wipe iru awọn nnkan bayii yoo ṣẹlẹ ni akoko ọlaju wa yii ṣęfę. Lootọ ni wipe imọlẹ nla ninu imọ, iwuwasi, ati ẹsin, n tan si ori iran yii. Ninu Ọrọ Mimọ Ọlọrun, a ti tan imọlẹ lati ọrun sori aye. Ṣugbọn a nilati ranti wipe bi imọlẹ ba ti pọ to, bęę ni okunkun awọn ti wọn ba ṣi i lo, ti wọn tun kọ ọ silẹ a ti pọ to.

Kikọ ękọ Bibeli pẹlu adura a fihan awọn Protestant ohun ti ijọ padi jẹ gan, yoo si jẹ ki wọn korira rẹ, ti wọn yoo si kọ ọ silẹ; ṣugbọn ọpọlọpọ ni wọn gbọn ninu ero wọn ti wọn ko ni idi lati wa Ọlọrun pẹlu irẹlẹ ki a baa le dari wọn sinu otitọ. Bi o tilẹ jẹ wipe wọn n gbe ara wọn ga nitori ọlaju wọn, wọn jẹ ope ninu ọrọ Ọlọrun ati nipa agbara Ọlọrun. Wọn nilati wa awọn ọna lati pa ẹri ọkan wọn lẹnu mọ, wọn n wa eyi ti ko ni i ṣe pẹlu ohun ẹmi ni ọna to pọ ti ko si nilo irẹlẹ pupọ. Ohun ti wọn n fẹ ni ọna ti yoo mu ki wọn gbagbe Ọlọrun ṣugbọn ti a o gba gęgę bi ọna lati maa ranti Rẹ. Ijọ padi mọ ọna lati ba awọn aini wọnyi pade. A ṣe e fun ęgbę eniyan meji ti o fęrę ko gbogbo aye ja—awọn ti wọn fẹ ki iṣẹ ọwọ wọn o gba wọn la, ati awọn ti wọn fẹ ki a gba wọn la ninu ẹṣẹ wọn. Nibi ni aṣiri agbara rẹ wa.

A ti fihan wipe akoko okunkun ninu imọ ran aṣeyọri ijọ padi lọwọ. A a tun fihan wipe akoko imọlẹ nla nipa imọ ran aṣeyọri rẹ lọwọ pẹlu. Ni awọn ọdun ti o kọja sẹyin, nigba ti awọn eniyan ko ni ọrọ Ọlọrun ti wọn ko si ni imọ otitọ, a di wọn loju, a si ko ọpọlọpọ sinu idękun, ti wọn ko ri àwọn ti a dę fun ẹṣẹ wọn. Ninu iran yii, ọpọlọpọ wa ti itansan ironu eniyan kọ mọna mọ loju, “eyi ti a n fi eke pe ni imọ;” wọn ko ri awọn naa, wọn si n rin lọ taara a fi bi ẹni ti a di loju. Ọlọrun ṣe e ki eniyan o ri agbara imọ rẹ gęgę bi ębun lati ọdọ Ẹlęda rẹ ki o si lo o fun iṣẹ otitọ ati ododo, ṣugbọn nigba ti a ba fęran igberaga

ati ọkanjuwa, ti eniyan si gbe ero rẹ ga ju ọrọ Ọlọrun lọ, nigba naa, imọ rẹ a ṣiṣẹ buburu ju aimọkan lọ. Bayi ni awọn imọ eke ti ode oni, eyi ti o n sẹ igbagbọ inu Bibeli, yoo ṣe ṣe aṣeyọri ni pipese ọna silẹ fun titẹwọ gba ijọ padi pẹlu awọn aṣa rẹ ti wọn wuni, gẹgẹ bi fifi imọ pamọ ti ṣe ni ṣiṣi ọna silẹ fun igbega rẹ ni Akoko oju Dudu.

Ninu awọn ẹgbẹ ti wọn wa ni United States nisinsinyii, ti wọn n fẹ lati ri atilẹyin ilu fun agbekalẹ ati aṣa ijọ, awọn Protestant n tẹle igbesẹ awọn atẹle popu. Rara, ju eyi lọ, wọn n ṣi ọna silẹ fun ijọ padi lati ri agbara ti o padanu ni Europe ni Protestant Amẹrika. Ohun ti o si mu ki ẹgbẹ yii o ṣe pataki ni wipe erongba wọn ni pato ni pe ki a fi ofin muni pa ọjọ kini ọsẹ mọ—aṣa ti o ti ọdọ Romu wa, eyi ti o sọ wipe oun ni ami aṣe oun. Ẹmi ijọ padi—ẹmi ibarẹ pẹlu aṣa aye, ibọwọfun aṣa eniyan ju ofin Ọlọrun lọ—ni o n wọ awọn ijọ Protestant ti o si n dari wọn lati ṣe iṣẹ gbigbe Sọnde ga, eyi ti ijọ padi ṣe ṣaaju wọn.

Bi ẹni ti o n ka iwe yii ba fẹ ni oye awọn ohun elo ti a o lo ninu ijakadi ti n bọ laipẹ, ohun ti o nilati ṣe ni ki o tọpasẹ akọsilẹ nipa ọna ti Romu lo fun ohun kan naa ni atẹyinwa. Bi yoo ba mọ bi awọn atẹle popu ati awọn Protestant a ṣe lẹdi apo pọ lati jẹ awọn ti wọn ba kọ ikọni wọn silẹ niya, jẹ ki o wo ẹmi ti Romu fihan si ọjọ Isinmi ati awọn ti wọn duro ti i.

Aṣẹ ọba, igbimọ apapọ ati ilana ijọ ti agbara oṣelu mu duro ni ọna ti ọjọ isin ibọrisa yii fi de ipo ọla ninu ẹsin Kristẹni. Ọna akọkọ ti a fi fi ofin mu gbogbo eniyan pa ọjọ kini ọsẹ mọ ni ofin ti Constantine ṣe (AD 321). Aṣẹ yii mu ki awọn eniyan inu ilu o sinmi "ni ọjọ ọlọwọ oorun," ṣugbọn o gba awọn ti n gbe igberiko laaye lati tẹsiwaju ninu iṣẹ wọn. Bi o tilẹ jẹ wipe aṣẹ ibọrisa ni patapata, lẹyin ti ọba Costantine fi ẹnu gba ẹsin Kristẹni tan ni o ṣe ofin yii.

Aṣẹ ọba ko kun oju oṣuwọn to lati yi aṣẹ Ọlọrun pada, Eusebius, bisọbu ti n wa oju rere awọn ijoye, ti o si jẹ ọrẹ pataki ati asọrọ didun si Constantine, sọ wipe Kristi ti yi ọjọ Isinmi pada si Sọnde. A ko funni ni ẹri kan ṣoṣo ninu Iwe Mimọ lati gbe ikọni tuntun yii lẹsẹ. Eusebius funra rẹ ni aimọ fi ọwọ si eke ti o wa nibẹ ti o si tọka si ẹni ti o fa iyipada naa. O sọ pe, "Ohun gbogbo ti o ba yẹ lati ṣe ni ọjọ Isinmi, awọn wọnyi ni a ti gbe wa si ọjọ Oluwa." Ṣugbọn igbagbọ nipa ọjọ Sọnde pẹlu bi ko ti lẹsẹ nilẹ to, mu ki awọn eniyan o nigboya lati tẹ ọjọ Isinmi Oluwa loju. Gbogbo awọn ti wọn fẹ lati ni iyi loju aye gba ọjọ isinmi gbogboogbo naa.

Bi ijọ padi ti n fẹsẹ mulẹ si, o n tẹsiwaju ninu iṣẹ rẹ lati gbe Sọnde ga. Fun igba diẹ awọn eniyan n ṣiṣẹ agbẹ nigba ti wọn ko ba lọ si ile ijọsin, ti wọn si n ri ọjọ keje gẹgẹ bi ọjọ Isinmi. Ṣugbọn diẹdiẹ ni wọn ṣe ayipada naa. A ko faaye gba awọn ti wọn wa ninu ipo mimọ lati

ṣe idajọ lori ọrọ ilu kankan ni ọjọ Ṣọnde. Laipẹ a pa gbogbo eniyan, ipokipo yoo wu ki wọn wa, laṣẹ lati maṣe ṣe iṣẹ kankan bi wọn ko ba fẹ san owo itanran, eyiini fun ominira, ati bi iranse ko ba fẹ ki a na oun ni pasan. A tun paṣẹ wipe a yoo jẹ ọlọrọ niya nipa pipadanu aabọ ohun ini rẹ; ati nikẹyin, a o sọ ẹni ti ko ba ṣe igbọran di ẹru. A yoo le awọn ti ko ba ni ọrọ kuro ni ilu.

A tun ṣe ijẹri awọn iṣẹ iyanu pẹlu. Lara awọn iyanu ti a royin rẹ ni agbẹ kan ti o fẹ ro oko rẹ ni ọjọ Ṣọnde ti o fọ ohun ìroko rẹ, irin naa tamọ lọwọ, ti o si gbe bẹẹ fun ọdun meji, "si irora ati itiju."

Nigba ti o ṣe, popu paṣẹ ki awọn alufa o gba awọn ti n ba ọjọ Ṣọnde jẹ niyanju, oun si fẹ ki wọn lọ si ile ijọsin, ki wọn si gbadura, ki wọn ma baa ko ijamba nla ba ara wọn ati alabagbe wọn. Igbimọ awọn alufa kan sọrọ, ti a si n lo o lati igba yẹn, ani ti awọn Protestant n lo o pẹlu, wipe nitori ti mọnamọna bọ lu ẹnikan ti n ṣiṣẹ ni ọjọ Ṣọnde, o nilati jẹ ọjọ Isinmi. Awọn alufa sọ wipe, "O han gbangba bi inu Ọlọrun ko ti dun si bi wọn ko ti ka ọjọ yii si." A parọwa si awọn alufa ati oniwaasu, awọn ọba ati ijoye, ati gbogbo awọn olootọ lati "lo gbogbo agbara ati ipa wọn ki a le da ọjọ naa pada si ipọ ọla rẹ, ati fun ọla ẹsin Kristẹni, ki wọn fi tọkantọkan pa a mọ fun akoko ti n bọ."

Nigba ti aṣẹ igbimọ ko to, a rọ awọn alaṣẹ ilu lati pa aṣẹ ti yoo dẹru ba ọkan awọn eniyan ti yoo si fi ipa mu wọn lati ṣiwọ iṣẹ ni ọjọ Ṣọnde. Ninu ipade awọn alufa kan ti a ṣe ni Romu, gbogbo ipinu awọn ipade ti iṣaaju ni a fi ontẹ lu pẹlu agbara ati ọwọ ti o ju ti iṣaaju lọ. A ko wọn wọ inu ofin ijọ a si fi aṣẹ ilu ti i lẹyin ni gbogbo ibi ti wọn ti n ṣe ẹsin Kristẹni.

Sibẹ ki i ṣe itiju kekere ni aisi aṣẹ Iwe Mimọ fun pipa ọjọ Ṣọnde mọ ko ba wọn. Awọn eniyan beere ẹtọ ti awọn olukọ wọn ni lati kọ aṣẹ Jehofa silẹ, "Ọjọ keje ni ọjọ Isinmi Oluwa Ọlọrun rẹ," lati le bọwọ fun ọjọ oorun. Lati le funni ẹri ti Bibeli ko ni, a nilati da ọgbọn miran. Onitara oniwaasu ọjọ Ṣọnde kan, ni opin ọrundun kejila bẹ awọn ijọ ni England wo, ti awọn ẹlẹri ododo si koju ija si, iṣẹ rẹ ko leso, o si fi ilẹ naa silẹ fun igba diẹ, o n wa ọna miran lati fun awọn ikọni rẹ ni aṣẹ. Nigba ti o pada wa, o gbe ohun ti ko ni tẹlẹ dani, ninu iṣẹ rẹ lẹyin eyi, o ṣe aṣeyọri ti o pọ. O mu iwe kan wa ti o sọ wipe lati ọdọ Ọlọrun funra Rẹ ni o ti wa, eyi ti o ni aṣẹ ti a nilo lati pa ọjọ Ṣọnde mọ, pẹlu awọn ikilọ ti o lagbara lati dẹruba awọn alaigbọran. Akọsilẹ ti o ṣeyebiye yii—ti o jẹ ẹtan nla bii agbekalẹ ti o ti lẹyin—ni a sọ wipe o jabọ lati ọrun ti wọn si ri ni Jerusalẹmu, lori pẹpẹ St. Simon, ni Golgota. Ṣugbọn nitootọ, afin alufa ni Romu ni ibi ti o ti jade wa. Awọn alaṣẹ ijọ padi ri ẹtan ati ẹru gẹgẹ bi ohun ti o ba ofin mu nigba ti a ba lo o lati tan agbara ati ọrọ ijọ kalẹ.

Akọsilẹ naa fi ofin de iṣẹ lati wakati kẹsan, aago mẹta ni ọsan ọjọ Satide, titi di igba ti oorun ba yọ ni ọjọ Mọnde; a si sọ wipe opọlọpọ iṣẹ iyanu ni o ti aṣẹ rẹ lẹyin. A royin wipe ẹni ti o ṣiṣẹ kọja wakati ti a la kalẹ ni arun ẹgba. Alọgbado ti o lọ agbado rẹ ri, dipo iyẹfun, àgbàrá ẹjẹ ni o n jade wa, ti ọlọta naa si duro soju kan bi o tilẹ jẹ wipe omi n san daradara. Obinrin ti o gbe iyẹfun sinu ile idana gbe jade ni tutu, bi o tilẹ jẹ wipe ile idana naa gbona janjan. Ẹlomiran ti o pese iyẹfun rẹ silẹ lati gbe sinu ina ni wakati kẹta, ṣugbọn ti o pinu lati gbe pamọ di ọjọ Monde ri ni ọjọ keji wipe a ti sọ ọ di iyẹfun kekeeke, ti agbara Ọlọrun si ti mu ki o jinna. Ọkunrin kan gbe iyẹfun rẹ sinu ina lẹyin wakati kẹsan ọjọ ni ọjọ Satide ri nigba ti o bu u ni ọjọ keji, ti ẹjẹ n jade lati inu rẹ. Nipasẹ iru awọn itan arosọ eke ti ko boju mu wọnyi ni awọn ti n pa ọjọ Sọnde mọ ṣa ipa lati fi fi idi rẹ mulẹ wipe o jẹ mimọ.

Ni Scotland, bi ti ilẹ England, a bọwọ ti o ga julọ fun ọjọ Sọnde nipa siso o pọ mọ diẹ ninu ọjọ Isinmi atijọ. Ṣugbọn akoko ti a o pa mọ yatọ. Aṣẹ lati ọdọ ọba Scotland sọ wipe "a nilati ka ọjọ Satide lati aago mejila si mimọ," ati pe ẹnikẹni, lati akoko naa titi di aarọ Mọnde ko gbọdo ṣe iṣẹ ara kan.

Ṣugbọn pẹlu gbogbo ipa lati fi idi ọjọ kini ọsẹ mulẹ bi ọjọ mimọ, awọn atẹle popu funra wọn jẹwọ nigbangba nipa aṣẹ Ọlọrun ti o wa lẹyin ọjọ Isinmi, ati bi aṣa ti o bo o mọlẹ ṣe ti ọdọ eniyan wa. Ni ọrundun kẹrindinlogun, igbimọ ijọ padi sọ ọ ni kedere wipe: "Jẹ ki gbogbo Kristẹni ranti pe Ọlọrun ni o ya ọjọ keje si mimọ, ti ki si i ṣe awọn Ju nikan ni wọn gba a ti wọn si n pa a mọ, bikoṣe gbogbo awọn ti wọn n sọ pe awọn n jọsin Ọlọrun bi o tilẹ jẹ wipe awa Kristẹni ti yi ọjọ Isinmi wọn pada si ọjọ Oluwa." Awọn ti wọn n tẹ ofin Ọlọrun loju ko ṣe alaimọ iru iṣẹ ti wọn n ṣe. Wọn mọọmọ n gbe ara wọn ga ju Ọlọrun lọ.

Apejuwe ti o yanilẹnu nipa iṣesi Romu si awọn ti ko ba fi ohun ṣọkan pẹlu rẹ ni a ri ninu inunibini rẹ si awọn Waldenses fun igba pipẹ, ti diẹ lara wọn pa ọjọ Isinmi mọ. Awọn miran jẹ iru iya kan naa nitori igbọran wọn si ofin kẹrin. Itan awọn ijọ ni Etiopia ati Abyssinia ṣe pataki pupọ. Laarin okunkun Igba Oju Dudu, araye ko mọ nipa awọn Kristẹni ni Aringungun Afrika, ti wọn si n jẹgbadun ominira lati fi igbagbọ wọn han fun opọlọpọ ọdun. Ṣugbọn ni ikẹyin, Romu mọ nipa wọn, a si fi ẹtan mu ki ọba Abyssinia o gba popu gẹgẹ bi aṣoju Kristi. Awọn ifayegba miran tẹle. A ṣe ofin ti ko faaye gbani lati pa ọjọ Isinmi mọ labẹ awọn ijiya to le. Ṣugbọn laipẹ onroro ijọ padi di ajaga ti o wuwo to bẹẹ gẹẹ ti awọn ara Abyssinia pinu lati ja kuro lọrun wọn. Lẹyin ijakadi ti o lagbara, a le awọn atẹle Romu kuro ni ilẹ wọn, a si da igbagbọ atijọ pada. Inu awọn ijọ dun fun ominira wọn, wọn ko

si gbagbe ẹkọ ti wọn kọ nipa ẹtan, igbonara ẹsin, ati agbara onroro Romu. O tẹ wọn lọrun ki wọn wa ni awọn nikan ninu ilẹ wọn, ki awọn Kristẹni yoku ma mọ nipa wọn.

Awọn ijọ ni Africa gba ọjọ Isinmi gẹgẹ bi ijọ padi ti gba a ki o to yapa patapata. Nigba ti wọn pa ọjọ keje mọ ni igbọran si ofin Ọlọrun, wọn ki i ṣe iṣẹ ni ọjọ Sọnde ni ibamu pẹlu aṣa ijọ. Lẹyin ti o gba agbara ti o ga julọ, Romu tẹ ọjọ Isinmi Ọlọrun loju lati le gbe aṣẹ tirẹ ga; ṣugbọn awọn ijọ Afrika, ti wọn wa ni ifarasin fun bi ẹgbẹrun ọdun kan, ko pin ninu iyapa rẹ. Nigba ti wọn bọ si ọwọ akoso Romu, a fi ipa mu wọn lati kọ ọjọ Isinmi otitọ silẹ, wọn si gbe ọjọ isinmi eke ga; ṣugbọn ni kete ti wọn gba ominira wọn, wọn pada lati ṣe igbọran si ofin kẹrin.

Awọn akọsilẹ nipa atẹyinwa yii fihan kedere ikorira ti Romu ni si ọjọ Isinmi tootọ ati awọn ti n ṣe atilẹyin rẹ, ati ọna ti o lo lati buyi fun aṣa ti o da silẹ. Ọrọ Ọlọrun kọni wipe awọn iṣẹlẹ wọnyi yoo tun ṣẹlẹ bi awọn ara Roman Katoliki ati Protestant ba ti parapọ lati gbe ọjọ Sọnde ga.

Asọtẹlẹ Ifihan 13 sọ wipe agbara ẹranko ti o ni iwo bi ọdọ aguntan yoo mu "aye ati awọn ti n gbe inu wọn" o jọsin ẹsin ijọ padi—eyi ti a fi ẹranko "ti o dabi amọtẹkun" juwe. Ẹranko ti o ni iwo meji yii tun sọ "fun awọn ti n gbe lori ilẹ aye ki wọn ya ere fun ẹranko naa;" ati siwaju si, yoo paṣẹ fun gbogbo eniyan, "ati kekere ati nla, ọlọrọ ati otoṣi, ominira ati onde," lati gba ami ẹranko naa. Ifihan 13:11—16. A ti fihan wipe United States ni agbara ti ẹranko ti o ni iwo bi ọdọ aguntan naa duro fun, asọtẹlẹ yii yoo si wa si imuṣẹ nigba ti United States ba fi ofin muni pa ọjọ Sọnde mọ, eyi ti Romu ri gẹgẹ bi ohun pataki ti o jẹ ami agbara rẹ. Ṣugbọn ki i ṣe United States nikan ni yoo wa ninu igbọran si popu yii. Agbara Romu ninu awọn orilẹ ede ti wọn fi igba kan ṣe igbọran si ri si wa sibẹ. Asọtẹlẹ si sọ fun wa wipe agbara rẹ yoo pada wa. "Mo ri ọkan ninu awọn ori rẹ ti o ni ọgbẹ aṣapa; a si ti wo ọgbẹ aṣapa rẹ san: gbogbo aye si n fi iyanu tẹlẹ ẹranko naa." Ẹsẹ 3. Igba ti a fun ni ọgbẹ aṣapa yii tọka si akoko ti popu ṣubu ni 1798. Lẹyin eyi, woli naa sọ pe, "a wo ọgbẹ aṣapa rẹ san: ti gbogbo aye si n fi iyanu tẹle ẹranko naa." Pọlu sọ ọ ni gbangba wipe "ọkunrin ẹṣẹ," yoo wa titi di akoko ipadabọ lẹẹkeji. 2 Tẹsalonika 2:3—8. Titi di opin akoko, yoo tẹsiwaju ninu iṣẹ itanjẹ. Onifihan si sọ, nigba ti o n tọka si wipe: "Gbogbo awọn ti n gbe lori ilẹ aye yoo si jọsin rẹ, awọn ti a ko kọ orukọ wọn sinu iwe iye." Ifihan 13:8. Ninu ilẹ Amẹrika ati Europe, popu yoo gba ijọsin ninu ọla ti a bu fun aṣa ọjọ Sọnde, eyi ti o duro lori aṣẹ ijọ Romu nikan ṣoṣo.

Lati aarin ọrundun kọkandinlogun, awọn ti n kẹkọ asọtẹlẹ ni United States ti fi ijẹri yii han fun araye. Ninu awọn iṣẹlẹ ti wọn n ṣẹlẹ bayii, a n ri ti asọtẹlẹ yii n yara kankan wa si imuṣẹ. Awọn olukọni Protestant sọ ẹri aṣẹ Ọlọrun kan naa fun pipa ọjọ Sọnde mọ, ati aisi ẹri Iwe Mimọ kan naa, gẹgẹ bi o ti ri fun awọn adari ijọ padi ti wọn ṣe arosọ awọn iṣẹ iyanu lati duro ni ipo aṣẹ Ọlọrun. A o tun sọ wipe a fi idajọ Ọlọrun bẹ awọn eniyan wo nitori ti wọn ko pa ọjọ Sọnde mọ; wọn tilẹ ti n sọ ọ na. Ẹgbẹ ti n ja fun fifi ofin muni pa ọjọ Sọnde mọ si n gbilẹ kan.

Ijọ Romu fi tiyanutiyanu jẹ alarekereke ati ọlọgbọn ẹwẹ. O le mọ ohun ti yoo ṣẹlẹ, o duro de akoko rẹ, ni riri wipe awọn ijọ Protestant n jọsin rẹ nipa gbigba ọjọ isinmi eke ati pe wọn tun n wa ọna lati fi ofin muni pa a mọ pẹlu ọna ti oun funra rẹ lo ni aye atijọ. Awọn ti wọn kọ imọlẹ otitọ silẹ yoo wa iranlọwọ ẹni ti o pe ara rẹ ni agbara ti ko le baku yii lati gbe agbekalẹ ti o bẹrẹ pẹlu rẹ ga. Bi yoo ti yara kankan wa ran wọn awọn Protestant lọwọ ki i ṣe ohun ti o nira lati ro. Tani o mọ bi wọn ti n ṣe pẹlu awọn ti wọn jẹ alaigbọran si ijọ bi awọn olori ijọ padi?

Ijọ Roman Katoliki, pẹlu gbogbo awọn aṣoju rẹ kaakiri gbogbo aye, jẹ ẹgbẹ nla kan labẹ akoso popu, ti a si n dari rẹ lati ṣe ifẹ rẹ. A kọ awọn atẹle rẹ ni gbogbo orilẹ ede aye lati ri wipe wọn ni ojuṣe lati ṣe igbọran si popu. Orilẹ ede yoo wu ki wọn ti wá, tabi ijọba wọn, wọn nilati ri aṣẹ ijọ gẹgẹ bi eyi ti o ga ju eyikeyi lọ. Lootọ wọn le jẹjẹ igbọran wọn fun ilẹ wọn, ṣugbọn lẹyin eyi ni ẹjẹ igbọran si Romu wa, ti o si yọ wọn kuro ninu gbogbo ẹjẹ ti o ba lewu si awọn erongba rẹ.

Itan sọ fun wa ọna alumọkọrọyi pẹlu aisinmi ti o n gba tẹ ara rẹ bọ inu iṣelu awọn orilẹ ede; nigba ti ẹsẹ rẹ ba si rinlẹ tan, a maa mu erongba rẹ ṣẹ, ani bi yoo ba tilẹ pa awọn alaṣẹ ati eniyan ibẹ run. Ninu ọdun 1204, popu Innocent III mu ki Peteru II ọba ilẹ Aragon o jẹ ẹjẹ yii: "Emi, Peteru, ọba awọn ara Aragon, jẹjẹ, mo si ṣe ileri lati jẹ olootọ ati olugbọran nigba gbogbo si oluwa mi, Pope Innocent, si awọn ara Katoliki ti yoo gun ori ipo lẹyin rẹ, ati Ijọ Romu, ati lati fi ododo pa ijọba mi mọ ninu igbọran si, ni igbeja igbagbọ Katoliki, ati ṣiṣe inunibini si awọn ẹlẹkọ odi." Eyi wa ni ibamu pẹlu igbagbọ nipa agbara alufa Romu "wipe o bofin mu fun lati yọ ọba loye" ati "pe o le sọ fun awọn ọmọ ilu lati maṣe ṣe igbọran si adari ti ki i ṣe olododo."

Ẹ si jẹki a ranti wipe Romu n fọnnu wipe oun ko yipada ri. Igbagbọ Gregory VII ati Innocent III si ni igbagbọ Ijọ Roman Katoliki. Bi o ba ni iru agbara lati ṣe bẹẹ ni, yoo ṣe wọn pẹlu gbogbo ipa gẹgẹ bi o ti ṣe ni atẹyinwa. Awọn Protestant ko ni oye pupọ nipa ohun ti wọn n ṣe nigba ti wọn ro lati wa iranlọwọ Romu ninu iṣẹ ati gbé ọjọ Sọnde

ga. Nigba ti wọn n mu erongba wọn ṣẹ, afojusun Romu ni lati fi idi agbara rẹ mulẹ lẹẹkansi, lati gba akoso ti o sọnu pada. Ẹ jẹki a fi idi ofin naa mulẹ ni United States wipe ijọ le lo tabi ṣe akoso agbara ilu, wipe a le fi ofin ijọba de ojuṣe ẹsin, ni kukuru wipe aṣẹ ijọ ati ti ijọba ni ki o ṣe akoso ẹri ọkan, iṣẹgun Romu ninu orilẹ ede yii a daju.

Ọrọ Ọlọrun ti funni ni ikilọ nipa ewu ti n bọ yii; ẹ jẹ ki a ṣe aigbọran si eyi, awọn Protestant a wa kọ nipa ohun ti erongba Romu jẹ gan an, ayafi wipe a ti pẹ ju lati sa asala kuro ninu idẹkun naa. Ninu idakẹrọrọ, agbara rẹ n pọ si. Ikọni rẹ n fi ipa wọn han ninu gbọngan awọn aṣofin, ninu ile ijọsin, ati ninu ọkan awọn eniyan. O n kọ ile nla si awọn ilu ti o farasin nibi ti yoo ti tun awọn inunibini atẹyinwa rẹ ṣe. Ni ikọkọ ati aifiyesi, o n fun awọn agbara rẹ lokun lati le mu erongba rẹ ṣe nigba ti akoko ba to fun lati ṣiṣẹ. Gbogbo ohun ti o n fẹ ni anfani ti o tọ, a si ti n fun ni eyi. Laipẹ a o ri, a o si mọ ohun gbogbo ti erongba Romu jẹ gan an. Ẹnikẹni ti yoo ba gbagbọ ti yoo si ṣe igbọran si ọrọ Ọlọrun yoo ri ẹgan ati inunibini.

36

Ikọlu Ti N Bọ

Oję erongba Satani lati bi ofin Ọlọrun wo lulę lati igba ti ijakadi nla naa ti bęrę ni ọrun. Nitori a ti le ṣe eleyi, ni o fi ṣọtę si Ẹlęda, bi o tilę jẹ wipe a le kuro ni ọrun, o mu ki ijakadi kan naa o tęsiwaju lori ilę aye. Lati le tan eniyan jẹ ati lati dari wọn lati ru ofin Ọlọrun, ni afojusun ti o n le laifaseyin. Boya a ṣe eyi nipa kikọ gbogbo ofin silę, tabi kikọ ọkan ninu awọn ilana rę silę, ohun kan naa ni yoo jasi nikęyin. Ẹni ti o ba jębi “ninu ohun kan” kęgan gbogbo ofin, ipa ati apęęrę wa ni ęba irekọja; o “jębi gbogbo rẹ.” Jakọbu 2:10.

Ni wiwa lati ko ęgan ba ofin Ọlọrun, Satani ti yi awọn ikọni Bibeli sodi, nipa eyi a si ti fi eke sinu igbagbọ ọpọlọpọ ti wọn sọ pe awọn gba Iwe Mimọ gbọ. Ijakadi nla ti o kęyin laarin otitọ ati eke jẹ ijakadi ti o kęyin ninu ijakadi ọlọjọ pipę nipa ofin Ọlọrun. A n wọ inu ogun naa lọ bayii—ogun laarin ofin eniyan ati ilana Jehofa, laarin ẹsin Bibeli ati ẹsin aṣa ati itan arosọ.

Awọn agbara ti yoo parapọ lati tako otitọ ati ododo ninu ijakadi yii n fi gbogbo agbara ṣiṣę bayii. A ko ka ọrọ mimọ Ọlọrun, ti a fi fun wa pęlu iye owo ijiya ati ęję si. Bibeli wa ni arọwọto gbogbo eniyan, ṣugbọn iwọnba awọn perete ni wọn gba a gęgę bi adari igbesi aye. Aigbagbọ n gbilę ni ọna ti o banilęru, ki i ṣe ninu aye nikan, ṣugbọn ninu ijọ pęlu. Ọpọlọpọ ni wọn n sę awọn igbagbọ ti wọn jẹ opo igbagbọ Kristęni. Itan dida aye, bi awọn onkọwe ti a mi si ti gbe kalę, iṣubu eniyan, iwęnumọ, ati bi ofin Ọlọrun ti wa titi lae ni awọn ti wọn pe ara wọn ni Kristęni ti kọ silę, boya ni gbogbo rę pata tabi ni abọ. Ọgọọrọ awọn ti wọn n gbe ara wọn ga ninu ọgbọn ati ominira wọn ri gęgę bi ami ailera lati ni igbękęle patapata ninu Bibeli, wọn ro wipe

ami ẹbun ti o ga ati imọ ni lati ṣe awawi eke si Iwe Mimọ, ati lati ṣe alaye awọn otitọ nla inu rẹ gẹgẹ bi ohun ẹmi ti ko ni i ṣe pẹlu wa. Ọpọ awọn oniwaasu ni wọn n kọ awọn eniyan wọn, ti ọpọlọpọ ọjọgbọn ati olukọ n kọ awọn akẹkọ wọn, wipe a ti yi ofin Ọlọrun pada tabi pe a ti sọ di asan, a si ro wipe awọn ti wọn ri ohun ti o wi gẹgẹ bi eyi ti o si lagbara ti o si yẹ ki a ṣe igbọran si wọn bi wọn ti sọ ni o yẹ fun ẹgan ati ifi-ṣe-ẹlẹya.

Ni kikọ otitọ silẹ, awọn eniyan n kọ Ẹni ti O kọ ọ silẹ. Ni titẹ ofin Ọlọrun loju, wọn n sẹ aṣẹ Ẹni ti O n funni lofin. O rọrun lati sọ igbagbọ ati ero eke di orisa gẹgẹ bi a ti n ṣe si okuta tabi igi. Nipa fifi Ọlọrun han ni ọna ti ko tọ, Satani n dari eniyan lati wo O pẹlu iwa ti ko bojumu. Pẹlu ọpọlọpọ, a ti gbe orisa ironujinlẹ ka ori itẹ dipo Jehofa; nigba ti o jẹ wipe awọn perete ni wọn n jọsin Ọlọrun alaaye, gẹgẹ bi a ti fihan ninu ọrọ Rẹ, ninu Kristi, ati ninu iṣẹ ohun ti a da. Ọpọ eniyan ni wọn n sọ ẹda di Ọlọrun ti wọn si n ṣe Ọlọrun gẹgẹ bi ẹda. Ẹsin ibọrisa wa ninu ẹsin Kristẹni loni gẹgẹ bi o ti wa laarin awọn ọmọ Isreali ni akoko Elija, bi o tilẹ jẹ wipe o wa ni ọna ti o yatọ. Ọlọrun ọpọlọpọ awọn ti wọn pe ara wọn ni ọlọgbọn eniyan, awọn alaronujinlẹ, akewi, oloṣelu, akọroyin—ọlọrun awọn ẹgbẹ ọlaju, ti ile ẹkọ giga ati kọlẹji, ati ti awọn ile ẹkọ miran ti a ti n kọni nipa Ọlọrun—fi diẹ san ju Baali, ọlọrun oorun awọn ara Foenisia lọ.

Ko si aṣiṣe ti awọn Kristẹni gba ti o fi igboya tako aṣẹ Ọrun, ko si eyi ti o tako iṣọwọronu, ko si eyi ti o lewu ninu ayọrisi rẹ, bi ikọni ode oni, ti o yara kankan n tan kalẹ, wipe ofin Ọlọrun ko ni aṣẹ lori eniyan mọ. Gbogbo orilẹ ede ni o ni ofin rẹ, eyi ti a gbọdọ bọwọ fun, ki a si ṣe igbọran si; ko si ijọba ti o le wa laisi wọn; njẹ a wa le ro wipe Ẹlẹda ọrun ati aye ko ni ofin lati ṣe akoso awọn ohun ti a da bi? Ẹ jẹ ki a ro o wipe awọn oniwaasu nla kan sọ ọ ni gbangba wipe awọn ofin to n ṣe akoso ilẹ wọn ti o tun daabo bo ẹtọ awọn ọmọ ilu ko ni aṣẹ mọ—wipe wọn din ominira awọn eniyan ku, nitori naa a ko gbọdọ ṣe igbọran si wọn, bawo ni a o ti gba wọn laaye lori pẹpẹ to? Ṣugbọn ṣe o jẹ ẹṣẹ ti o lewu ki a kọ ofin ilu ati ti orilẹ ede silẹ, ju ki a tẹ awọn ofin ti wọn jẹ ipilẹ fun gbogbo ijọba silẹ lọ?

Yoo dara ki awọn orilẹ ede o pa ofin wọn run, ki wọn si gba awọn eniyan laaye ki wọn ṣe bi wọn ti fẹ ju ki Alaṣẹ gbogbo aye o fagi le ofin Rẹ lọ, ki o si fi aye silẹ laini odiwọn lati da ọdaran lẹbi ati lati da olugbọran lare. Ṣe a fẹ mọ ayọrisi sisọ ofin Ọlọrun di asan? A ti dan wo ri. Awọn ohun ti wọn ṣẹlẹ ni France nigba ti igbagbọ wipe ko si Ọlọrun jẹ agbara iṣakoso jẹ eyi ti o banilẹru. Nigba naa ni a fihan araye wipe lati kọ idena ti Ọlọrun gbe kalẹ silẹ ni lati gba aṣẹ lọwọ onroro ti o nika julọ. Nigba ti a ba kọ odiwọn otitọ silẹ,

a ṣi ọna silẹ fun ọmọ alade iwa buburu lati fi idi agbara rẹ mulẹ ninu aye.

Nibikibi ti a ba ti kọ ilana Ọlọrun silẹ, ẹṣẹ ko ni fi ara han bi ẹṣẹ mọ, bẹẹ ni ododo ko ni wuni. Awọn ti wọn kọ lati tẹriba fun iṣejọba Ọlọrun ko yẹ rararara lati ṣe akoso ara wọn. Nipasẹ ikọni buburu wọn a gbin ẹmi aigbọran sinu ọkan awọn ọmọde ati ọdọ, ti wọn ko ni suuru lati gba ki a dari wọn tẹlẹ; awujọ ti ko ni ofin, ti ko si ni akoso ni yoo jẹ ayọrisi rẹ. Nigba ti wọn n kẹgan igbagbọ awọn ti wọn ṣe igbọran si ọrọ Ọlọrun, ọpọ awọn eniyan n yara kankan lati gba itanjẹ Satani. Wọn jọwọ ara wọn fun ifẹkufẹ ara ati awọn ẹṣẹ ti wọn pe idajọ wa si ori awọn alaigbagbọ.

Awọn ti wọn kọni lati fi oju tinrin wo ofin Ọlọrun n gbin aigbọran lati kore aigbọran. Ẹ jẹki a kọ idiwọ ti ofin Ọlọrun ṣe funni silẹ patapata, laipẹ a o si kọ ofin eniyan silẹ. Nitori pe Ọlọrun ko fi aaye gba iwa aiṣootọ, oju kokoro, irọ, ati irẹniiẹ, awọn eniyan ṣetan lati tẹ ofin Rẹ loju nitori ti o jẹ idiwọ fun kíkó aye ti wọn fẹran jọ; ṣugbọn ayọrisi kikọ awọn ofin wọnyii silẹ yoo jẹ eyi ti wọn ko ni ireti. Bi ofin ko ba de eniyan, kilode ti a o fi nilati bẹru lati dẹṣẹ? Ko ni si aabo fun ohun ini mọ. Awọn eniyan yoo gba ohun ini ẹnikeji wọn pẹlu ipa, awọn to ba lagbara julọ ni yoo jẹ ọlọrọ julọ. A ko ni bọwọ fun ẹmi funra rẹ. Majẹmu igbeyawo ko ni duro gẹgẹ bi aabo mimọ lati daabo bo idile mọ. Ẹni ti o ba ni agbara, bi o ba fẹ, yoo fi ipa gba iyawo alabagbe rẹ. A o kọ ofin karun silẹ pẹlu ikẹrin. Awọn ọmọ ko ni bẹru lati gba ẹmi awọn obi wọn bi wọn yoo ba ri ifẹ ọkan idibajẹ wọn ṣe nipa ṣiṣe bẹẹ. Aye ọlaju yoo di iwo ọlọṣa ati apaniyan, alaafia, isinmi ati iduunu yoo kuro lori ilẹ aye.

Gẹgẹ bi a ti ri na, ikọni wipe eniyan ko nilo lati ṣe igbọran si ofin Ọlọrun mọ ti ko aarẹ ba agbara ojuṣe iwa rere, o si ṣi ilẹkun agbara ẹṣẹ sori aye. Ailofin, imuti, ati iwa ibaje n wọle wa gẹgẹ bi igbi omi àgbàrá. Ninu idile, Satani n ṣiṣẹ. Asia rẹ n fẹ lẹlẹ, ani ninu ile awọn ti wọn pe ara wọn ni Kristẹni. Ilara, ero buburu, iwa agabagebe, iyapa, ijowu, ija, aika ifọkantan ọlọwọ si, titẹ ifẹkufẹ ara lọrun n wa. Gbogbo ilana igbagbọ ẹsin ati ikọni, eyi ti i ba jẹ ipilẹ ati ilana fun awujọ, dabi ẹru nla ti n mi dugbẹdugbẹ ti o ṣetan lati wo lulẹ. Nigba ti a ba ju eyi ti o buru julọ ninu awọn ọdaran sinu ọgba ẹwọn fun ẹṣẹ wọn, a n fiyesi wọn, a si n fun wọn ni ẹbun afi bi ẹnipe wọn ṣe ohun ti o dara. A n ṣe ikede iwa ati ẹṣẹ wọn lona ti o ga. Awọn ile itẹwe n ṣe atẹjade iwa buburu ti o ṣi ni lara ni kikun, nipa eyi wọn n fi iwa irẹniiẹ, ole, ati ipaniyan n lọ awọn miran, Satani si n yọ ninu aṣeyọri ète buburu rẹ. Onfa iwa ibi, pipaniyan lainidi, bi iwa ailekora-ẹni-nijanu ti pọ ni ọna ti o lewu, ati iwa aiṣedeede ni iye rẹ ati ni ipele rẹ, yẹ ki o ta gbogbo

ẹni ti o ba bẹru Ọlọrun ji, lati beere ohun ti a le ṣe lati dawọ igbi iwa buburu duro.

Ile idajọ kun fun iwa ibajẹ. Awọn alaṣẹ n ṣiṣẹ nitori ifẹ fun ere ati ifẹ faaji. Ailekora-ẹni-nijanu ti fọ ọpọlọpọ niye debi pe Satani ti fẹrẹ gba akoso lori wọn tan patapata. Awọn onidajọ ti dibajẹ, wọn n gba abẹtẹlẹ, a si n tan wọn jẹ. Iwa ọmuti ati ainiwọntuwọnsi, ifẹ ara, ilara, aisootọ lorisirisi, ni o wa laarin awọn ti n ṣiṣẹ ofin. "Idajọ duro jinna réré: nitori ti otitọ ti ṣubu ninu ilu; idọgba ko si le wọle." Aisaya 59:14.

Ẹṣẹ ati okunkun ẹmi ti o gbilẹ labẹ akoso Romu jẹ abayọri ti a ko le dena nitori bi o ti ṣe tẹ Iwe Mimọ ri; ṣugbọn nibo ni a ti le ri idi fun aigbagbọ ti o gbilẹ kan, kikọ ofin Ọlọrun silẹ, ati iwa ibajẹ ti o tẹle, labẹ ina iyinrere ti n jo kikankikan ni akoko ominira ẹsin? Ni bayi, Satani ko le fi aye si abẹ akoso rẹ nipa fifi Iwe Mimọ pamọ, o wa ọna miran lati ṣe ohun kan naa. Biba igbagbọ inu Bibeli jẹ yoo ran an lọwọ gẹgẹbi pipa Bibeli run funra rẹ. Nipa mimu igbagbọ wipe ofin Ọlọrun ko lagbara mọ wa, o n ṣe aṣeyege ni didari awọn eniyan lati dẹṣẹ bi ẹnipe wọn jẹ alaimọkan patapata si awọn ilana rẹ. Ni akoko yii, bii ti awọn igba to ti kọja, o ṣiṣẹ nipasẹ ijọ lati mu ero rẹ ṣẹ. Ẹgbẹ ẹsin ti ode oni kọ lati tẹti si awọn otitọ ti ko gbajugbaja ti a fihan kedere ninu Iwe Mimọ, ati pe ni titako wọn, wọn lo iṣọwọtumọ ati ọrọ ti o gbin irugbin aigbagbọ kaakiri. Ni riro mọ aṣiṣe ijọ padi niti wipe a bi aiku mọni ati pe eniyan si ni imọ ninu iku, wọn ti kọ aabo kan ṣoṣo ti wọn ni lati tako ẹtan ibẹmilo silẹ. Ikọni ijiya ainipẹkun ti mu ki ọpọlọpọ o sẹ igbagbọ ninu Bibeli. Ati bi a ti n kọ awọn eniyan ni ojuṣe wọn si ofin kẹrin, a ri wipe a sọ funni lati pa ọjọ keje mọ, gẹgẹ bi ẹna kan ṣoṣo lati yọ ara wọn kuro ninu ojuṣe ti wọn ko fẹ ṣe, ọpọ awọn olukọ ti wọn lokiki sọ wipe ofin Ọlọrun ko ni aṣẹ mọ. Wọn ju ofin Ọlọrun ati ọjọ Isinmi sọnu papọ. Bi iṣẹ atunṣe nipa ọjọ Isinmi ti n tẹsiwaju, ikọsilẹ ofin Ọlọrun yii lati maṣe pa ọjọ Isinmu mọ yoo fẹrẹ di kari aye. Awọn ikọni awọn olori ẹsin ti ṣi ilẹkun silẹ fun aigbagbọ, fun ibẹmilo, ati fun gigan ofin mimọ Ọlọrun, awọn olori wọnyii ni wọn ṣe okunfa fun iwa ẹṣẹ to wa ninu ẹsin Kristẹni.

Sibẹ, awọn wọnyi n sọ wipe iwa ibajẹ to n yara kankan tan kalẹ yii waye nitori bi a ti n ba eyi ti a n pe ni "Ọjọ Isinmi Kristẹni" jẹ, ati pe fifi ofin muni pa ọjọ Sọnde mọ yoo da iwa rere pada sinu awujọ. A n ṣe ikede yii, ni pataki julọ ni ilẹ Amẹrika, nibi ti a ti waasu igbagbọ nipa ọjọ Isinmi tootọ julọ. Nibi, iṣẹ iwọntuwọnsi, ọkan ninu iṣẹ atunṣe ìwà ti o lokiki to tun ṣe pataki julọ, ni a saba maa n sopọ mọ ẹgbẹ ti n ja fun ọjọ Sọnde, ti awọn ti n polongo rẹ si n fi ara wọn han gẹgẹ bi ẹnipe wọn n ṣe iṣẹ ti o dara fun awujọ, awọn ti wọn si kọ lati darapọ mọ wọn ni a pe ni ọta iwọntuwọnsi ati iṣẹ atunṣe. Ṣugbọn nitori pe

ẹgbẹ ti o fi idi aṣiṣe mulẹ darapọ mọ iṣẹ ti o dara funra rẹ, ko ni ki a fi oju rere wo aṣiṣe naa. A le fi majele pamọ nipa riro o pọ mọ ounjẹ ti o dara, ṣugbọn a ko yi iṣẹda rẹ pada. Dipo eyi, o tubọ lewu si ni, nitori pe a le jẹ ẹ laimọ. O jẹ ọkan lara awọn ete Satani lati da eke pọ mọ ọpọlọpọ otitọ lati le fun ni iyin. Awọn adari ẹgbẹ fun ọjọ Sọnde le kede iṣẹ atunṣe ti awọn eniyan nilo, awọn ẹkọ ti wọn wa ni ibamu pẹlu Bibeli, sibẹ niwọn igba ti wọn ba ṣi ni ohun kan ti o tako ofin Ọlọrun, awọn iranṣẹ Rẹ ko le darapọ mọ wọn. Ko si ohun ti o le dawọn lare lati kọ aṣẹ Ọlọrun silẹ fun ilana eniyan.

Nipasẹ aṣiṣe nla meji yii, aiku ọkan ati wipe ọjọ Sọnde jẹ mimọ, Satani yoo ko awọn eniyan si abẹ ẹtan rẹ. Nigba ti eyi akọkọ se ipilẹ fun ibẹmilo, eyi ti o kẹyin mu ibaṣepọ pẹlu Romu wa. Awọn Protestant United States yoo jẹ ẹni akọkọ lati na ọwọ wọn kọja ọgbun lati di ibẹmilo mu, wọn a na ọwọ wọn kọja koto nla lati so ọwọ pọ pẹlu agbara Romu; labẹ agbara irẹpọ mẹtẹẹta yii, orilẹ ede yii yoo tẹle isisẹ Romu lati tẹ ẹtọ si ẹri ọkan loju.

Bi ibẹmilo ti n farawe ẹsin Kristẹni afẹnujẹ ti ode oni, o ni agbara ti o pọ si lati tanniję ati lati dẹkun muni. Satani funra rẹ ti yipada, o n tẹle ilana ọlaju asiko yii. Yoo fi ara han gẹgẹ bi angẹli imọlẹ. Nipasẹ ohun elo ibẹmilo, a o ṣe iṣẹ iyanu, awọn alaisan a ri iwosan, ọpọlọpọ awọn iṣẹ iyanu ti a ko le sẹ ni yoo ṣẹlẹ. A ti bi awọn ẹmi naa ba ti n sọ wipe wọn gbagbọ ninu Bibeli, ti wọn si n bọwọ fun awọn agbekalẹ ijọ, a o gba iṣẹ wọn gẹgẹ bi ifarahan agbara Ọlọrun.

Ami idanimọ laarin awọn ti wọn pe ara wọn ni Kristẹni ati awọn alaiwabiọlọrun ti fẹrẹ parẹ tan. Awọn ọmọ ijọ fẹran awọn ohun ti aye fẹran, wọn si ṣetan lati darapọ mọ wọn, Satani si pinu lati so wọn pọ sinu ara kan ki o si fun iṣẹ rẹ lokun nipa gbígbá gbogbo wọn sinu ẹgbẹ ibẹmilo. Awọn atẹle popu ti wọn n fọnnu wipe iṣẹ iyanu jẹ ami pato lati mọ ijọ tootọ, yoo ṣe e tanjẹ ni kiakia nipasẹ agbara ti n ṣiṣẹ iyanu yii; ati awọn Protestant, nigba ti wọn ti kọ apata otitọ silẹ, a o tan wọn jẹ pẹlu. Awọn atẹle popu ati awọn araye bakan naa yoo gba afarawe iwabiọlọrun laisi agbara rẹ, wọn a si ri ninu ẹgbẹ nla yii iyipada araye ati gbigbe ẹgbẹrun ọdun ti a ti n reti fun igba pipẹ wọle.

Nipasẹ ibẹmilo, Satani fi ara han gẹgẹ bi ẹni ti o n ṣe araye loore, o n wo aisan awọn eniyan san, o si n sọ wipe oun n mu ilana ẹsin igbagbọ tuntun ti o dara wa; ṣugbọn bakan naa o n ṣiṣẹ lati pa wọn run. Awọn idanwo rẹ n dari ọpọlọpọ sinu iparun. Ainiwọntuwọnsi ki i muni ronu, titẹ ifẹ ara ẹni lorun, ija ati itajẹsilẹ a tẹle. Satani ni inudidun si ogun, nitori ti o n ru itara ti o buru julọ ninu ọkan soke, a wa gba awọn ẹni igbekun rẹ ti wọn ti kun fun iwa ibajẹ ati ẹjẹ sinu ayeraye. Erongba rẹ

ni lati ru awọn orilẹ ede soke lati ba ara wọn jagun, nitori nipa eyi a yi awọn ọkan kuro ninu iṣẹ imura silẹ lati le duro ni ọjọ Ọlọrun.

Satani n ṣiṣẹ nipasẹ awọn ohun inu aye lati le kore awọn ti ko mura silẹ. O ti kọ nipa aṣiri iṣẹda, o si n lo gbogbo agbara rẹ lati dari awọn nnkan wọnyi niwọn bi Ọlọrun ba ti gba a laaye to. Nigba ti a gba a laaye lati jẹ Jobu niya, ẹ wo bi ẹran ọsin, ati agbo ẹran, iranṣẹ, ile ati awọn ọmọ ṣe padanu, ti ajalu kan n tẹle ekeji lẹyẹ ò ṣọka. Ọlọrun ni o n daabo bo awọn ẹda Rẹ ti O si mọ odi yi wọn ka kuro lọwọ agbara apanirun. Ṣugbọn awọn Kristẹni ti fi ẹgan wọn han si ofin Jehofa, Oluwa a si ṣe ohun ti O kede wipe Oun yoo ṣe—yoo fa ọwọ ibukun Rẹ kuro ninu aye, yoo si mu aabo Rẹ kuro lori awọn ti wọn ṣọtẹ si ofin Rẹ, ti wọn n kọ awọn miran, ti wọn si n fi ipa mu wọn lati ṣe bẹẹ. Satani ní akoso lori gbogbo awọn ti Ọlọrun ko daabo bo. Yoo ṣe rere fun awọn kan, yoo bukun wọn lati tẹ iṣẹ rẹ siwaju, yoo si ko wahala ba awọn miran, a si mu ki awọn eniyan o gbagbọ wipe Ọlọrun ni o n jẹ wọn niya.

Nigba ti o n fi ara han fun awọn ọmọ eniyan gẹgẹ bi oluwosan nla ti o le wo gbogbo aisan wọn, yoo mu aisan ati ajalu wa, titi ti ilu nla a fi parun tan ti a si di ahoro. Ani bayii, o wa lẹnu iṣẹ. Ninu ijamba ati ajalu lori okun ati ilẹ, ninu ina nla, ẹfuufu lile ati yinyin alagbara, ninu iji, ikun omi, afẹfẹ, igbi omi, ilẹ riri, ni ibi gbogbo, ni orişirişi ọna, Satani n lo agbara rẹ. O n gba ikore ti o ti pọn danu, iyan ati inira a si tẹle. O n mu òórùn buburu wa sinu afẹfẹ, ti ọpọ eniyan si n ku nipasẹ ajakalẹ arun. Awọn abẹwo wọnyi a maa wa lemọlemọ a si maa lewu si. Iparun yoo wa lori eniyan ati ẹranko. “Ile aye n kẹdun o si n ṣa,” “awọn agberaga . . . ru. Aye pẹlu ti dibajẹ, nitori awọn olugbe inu rẹ; nitori ti wọn ti tàpá si ofin, wọn ti yi ilana pada, wọn si ti da majẹmu ayeraye.” Aisaya 24:4, 5.

Nigba naa ni atanniję nla naa a rọ awọn eniyan rẹ wipe awọn ti n sin Ọlọrun ni wọn n fa awọn iṣẹlẹ ibi wọnyi. Awọn ti wọn fa ibinu Ọlọrun yoo fi ẹsun gbogbo wahala wọn kan awọn ti igbọran wọn si ofin Ọlọrun jẹ ibawi atigbadegba fun awọn ẹlẹṣẹ. A o sọ wipe awọn eniyan n bi Ọlọrun ninu nipa biba isinmi ọjọ Sọnde jẹ; wipe ẹṣẹ ti mu àjálù wá, eyi ti ko ni ṣiwọ ayafi bi a ba fipa muni pa ọjọ Sọnde mọ; ati pe awọn ti n waasu nipa ofin kẹrin, ti wọn n tipasẹ eyi n ba ọjọ Sọnde jẹ, ni awọn ti n da eniyan laamu, ti wọn di idapada ojurere Ọlọrun ati ọrọ aye yii lọwọ. Bayi iru ẹsun ti a fi kan iranṣẹ Ọlọrun ni igba atijọ ni a o tunsọ, ati lori ohun kan naa ti a fi idi rẹ mulẹ daradara: “O si ṣe, nigba ti Ahabu ri Elija, Ahabu wi fun pe, Ṣe iwọ ni, ẹni ti n yọ ile Isreali lẹnu? Oun si da a lohun wipe, emi kọ ni o n yọ Isreali lẹnu; bikoṣe iwọ ati ile baba rẹ, ni ti wipe ẹyin ti kọ ofin Oluwa silẹ, ẹ si ti tẹle Baalimu.”

1 Awọn Ọba 18:17, 18. Bi ibinu awọn eniyan ba ṣe n ru soke nitori ẹsun eke yii, wọn a wuwa si awọn aṣoju Ọlọrun eyi ti yoo dabi eyi ti Isreali apẹyinda wu si Elija.

Agbara ti n ṣe iṣẹ iyanu ti o farahan nipasẹ ibẹmilo a ṣa ipa rẹ lati tako awọn ti wọn yàn lati gbọ ti Ọlọrun ju ti eniyan lọ. Ohùn lati ọdọ awọn ẹmi wa yoo sọ wipe Ọlọrun ti ran wọn lati fi aṣiṣe awọn ti wọn kọ ọjọ Sọnde silẹ han wọn, wọn a sọ pe a nilati ṣe igbọran si ofin orilẹ ede gẹgẹ bi ofin Ọlọrun. Wọn a kẹdun fun iwa ibajẹ nla ti o wa ninu aye, wọn a si kín ẹri awọn olukọ ẹlẹsin lẹyin wipe iwa ibajẹ ti o wa ninu ilu waye nitori pe a n ba ọjọ Sọnde jẹ ni. Ibinu nla ni a o fihan si awọn ti wọn kọ lati gba ẹri wọn.

Iṣọwọṣiṣẹ Satani ninu ijakadi ti o kẹyin yii pẹlu awọn eniyan Ọlọrun jẹ eyi kan naa ti o lo ni ibẹrẹ ijakadi nla naa ni ọrun. O sọ wipe oun fẹ lati jẹ ki ijọba Ọlọrun o fi ẹsẹ mulẹ, nigba ti o n ṣiṣẹ ni idakọnkọ lati bi i lulẹ. Iṣẹ gan an ti o n ṣe ni o fi ẹsun rẹ kan awọn angẹli ti wọn jẹ olootọ. Ilana itanjẹ kan naa ni o farahan ninu itan ijọ Romu. O sọ pe oun n ṣiṣẹ gẹgẹ bi aṣoju Ọrun, nigba ti o n wọna lati gbe ara rẹ ga ju Ọlọrun lọ ti o si n yi ofin Rẹ pada. Labẹ iṣakoso Romu, a pe awọn ti wọn jiya iku nitori iṣotitọ wọn si iyinrere ni aṣebi, a sọ wipe wọn wa ni iṣọkan pẹlu Satani; gbogbo ọna ti o ṣe e ṣe ni a lo lati ko itiju ba wọn, lati mu ki awọn eniyan o ri wọn, ani ki awọn funra wọn o ri ara wọn gẹgẹ bi ọdaran ti o buru julọ. Bẹẹ gẹgẹ ni yoo ṣe ri ni akoko yii. Nigba ti Satani n wọna lati pa awọn ti wọn bọwọ fun ofin Ọlọrun run, yoo jẹ ki a fi ẹsun kan wọn gẹgẹ bi awọn ti ko bu ọla fun Ọlọrun ti wọn si n fa idajọ Rẹ wa si ori aye.

Ọlọrun ki i fi ipa mu ifẹ tabi ẹri ọkan ẹni, ṣugbọn ohun ti Satani saba maa n lo—lati ni akoso lori awọn ti ko le tanjẹ—ni ifipamuni pẹlu iwa ika. Nipasẹ ẹru tabi agbara, o ṣe akitiyan lati ṣe akoso ẹri ọkan ki o si gba ijọsin fun ara rẹ. Lati ṣe eyi, o n ṣiṣẹ nipasẹ awọn alaṣẹ ẹsin ati oṣelu, o n mi si wọn lati fi ipa muni ṣe igbọran si ofin eniyan ni atako si ofin Ọlọrun.

Awọn ti wọn bọwọ fun ọjọ Isinmi Bibeli ni a o bawi gẹgẹ bi ọta ofin ati eto, wipe wọn n wo ohun ti n muni wuwa rere lawujọ lulẹ, wọn ṣe okunfa iwa rudurudu ati iwa ibajẹ, ati pe wọn n pe idajọ Ọlọrun wa si ori aye. Iwoye pẹlu otitọ inu wọn ni a o pe ni aigbọran, orikunkun ati ikẹgan ofin. A o fi ẹsun kan wọn wipe wọn ko fẹran ijọba. Awọn oniwaasu ti wọn sọ wipe a ko nilo lati ṣe igbọran si ofin Ọlọrun a waasu lori pẹpẹ wipe a ni ojuṣe lati ṣe igbọran si aṣẹ ilu gẹgẹ bi eyi ti Ọlọrun fi ọwọ si. Ni awọn ile aṣofin, gbọngan idajọ, a o fi awọn ti n pa ofin mọ han ni ọna ti ko tọ, a o si da wọn lẹbi. A o ṣi ọrọ wọn tumọ, a o tumọ erongba wọn ni ọna to buru julọ.

Bi awọn ijọ Protestant ti n kọ ọrọ Iwe Mimọ ti o han kedere ti o tun fi ofin Ọlọrun han silẹ, wọn a fẹ lati pa awọn ti wọn ko le fi Bibeli bi igbagbọ wọn wó lẹnu mọ. Bi o tilẹ jẹ wipe wọn fọ oju ara wọn si otitọ naa, wọn n ṣe nisinsinyii ohun ti yoo yọri si inunibini si awọn ti wọn fi tọkantọkan kọ lati ṣe ohun ti awọn Kristẹni yooku n ṣe, ni ṣiṣe igbọran si ọjọ isinmi popu.

Awọn alaṣẹ ijọ ati ilu a parapọ lati funni ni abẹtẹlẹ, lati parọwa si ni tabi lati fi ipa mu gbogbo eniyan lati bọwọ fun ọjọ Sọnde. Wọn a fi ofin aninilara rọpo aṣẹ Ọlọrun ti kò si nibẹ. Iwa ibajẹ inu oṣelu n ba ifẹ fun ododo ati ọwọ fun otitọ jẹ; ani ni ilẹ Amẹrika ti ominira wa, awọn alaṣẹ ati aṣofin, lati le ri oju rere awọn eniyan, a tẹ si ohun ti gbogbo aye n fẹ lati fi ofin de pipa ọjọ Sọnde mọ. A ko wa ni bọwọ fun ominira ọkan mọ, eyi ti o náni ni irubọ nla lati ni. Ninu ikọlu ti n bọwa laipẹ, a o ri imuṣẹ ọrọ woli naa: “Dragoni naa si binu gidigidi si obinrin naa, o si lọ ba eyi ti o ṣeku ninu iru ọmọ rẹ jagun, awọn ti n pa ofin Ọlọrun mọ, ti wọn si ni ẹri Jesu Kristi.” Ifihan 12:17.

37

Iwe Mimọ Gẹgẹ Bi Aabo

"Si ofin ati si ẹri: bi wọn ko ba sọ gẹgẹ bi ọrọ yii, nitori pe ko si imọlẹ ninu wọn ni." Aisaya 8:20. A dari awọn eniyan Ọlọrun sinu Iwe Mimọ gẹgẹ bi aabo wọn kuro lọwọ agbara awọn olukọ eke ati agbara atanniję awọn ẹmi okunkun. Satani lo gbogbo ọna ti o le lo lati di awọn eniyan lọwọ lati le ni imọ Bibeli nitori awọn ọrọ to da ṣaka to wa ninu rẹ fi awọn ẹtan rẹ han. Ni akoko gbogbo isọji iṣẹ Ọlọrun ọmọ alade iwa buburu n ṣiṣẹ takuntakun, o n lo gbogbo agbara nisinsinyii fun ijakadi ti o kẹyin pẹlu Kristi ati awọn atẹle Rẹ. Itanję nla ti o kẹyin yoo ṣi silẹ niwaju wa laipẹ. Aṣodi si Kristi yoo ṣe iṣẹ iyanu rẹ niwaju wa. Ayederu yii yoo fi ara jọ ojulowo debi pe ko ni ṣe e ṣe lati mọ iyatọ laarin wọn ayafi nipasẹ Iwe Mimọ. Ẹri wọn ni a o fi dan gbogbo ọrọ ati iṣẹ iyanu wo.

A o tako awọn ti wọn n gbiyanju lati ṣe igbọran si ofin Ọlọrun, a o si fi wọn ṣẹsin. Inu Ọlọrun nikan ni wọn ti le duro. Lati le farada idanwo ti o wa niwaju wọn, wọn nilati ni oye ifẹ Ọlọrun gẹgẹ bi a ti fihan ninu ọrọ Rẹ; ọna kan ṣoṣo ti wọn file bọwọ fun ni nini oye ti o tọ nipa iwa, iṣejọba, ati erongba Rẹ, ki wọn si wuwa ni ibamu pẹlu wọn. Awọn ti wọn ti fun iyè wọn lokun pẹlu awọn otitọ Bibeli nikan ni yoo le duro la ijakadi nla ti o kẹyin kọja. Idanwo ti n bẹ ọkan wo yoo wa si ọdọ gbogbo eniyan: Ṣe maa ṣe igbọran si Ọlọrun ju eniyan lọ? Akoko ipinu ku si dẹdẹ. Ṣe a ti fi ẹsẹ wa mulẹ sori apata ọrọ Ọlọrun ti ko le yẹ? N jẹ a ṣetan lati duro gbọin lati gbeja ofin Ọlọrun ati igbagbọ Jesu?

Ki a to kan an mọ agbelebu, Olugbala ṣe alaye fun awọn ọmọ ẹyin Rẹ wipe a o pa Oun ati pe Oun yoo jinde kuro ninu iboji, awọn

angẹli si wa nibẹ lati tẹ ọrọ naa mọ iye ati ọkan wọn. Ṣugbọn awọn ọmọ ẹyin n wa idasilẹ ti ara kuro ninu ajaga Romu, wọn ko le fi ara da ero wipe Ẹni ti wọn gbẹkẹle a ku iku itiju. Awọn ọrọ ti wọn nilo lati ranti kuro ninu ọkan wọn, nigba ti akoko idanwo de, o ba wọn ni aimurasilẹ. Iku Jesu ja ireti wọn kulẹ patapata afi bi ẹnipe ko kilọ fun wọn tẹlẹ. Bẹẹ gẹgẹ ninu awọn asọtẹlẹ, a ṣi ọjọ iwaju silẹ kedere fun wa gẹgẹ bi a ti ṣi silẹ fun awọn ọmọ ẹyin nipasẹ ọrọ Kristi. Awọn iṣẹlẹ ti wọn ni i ṣe pẹlu opin akoko oore ọfẹ ati iṣẹ imurasilẹ fun akoko idamu, ni a fihan kedere. Ṣugbọn ọpọ eniyan ko ni oye awọn otitọ pataki yii a fi bi ẹni pe a ko ṣe afihan wọn rara. Satani n ṣọna lati gba gbogbo ero ti yoo muni gbọn si igbala lọ, ti akoko wahala naa a si ba wọn ni aimurasilẹ.

Nigba ti Ọlọrun ba ran ikilọ ti o ṣe pataki to bẹẹ gẹẹ ti a ṣe afihan rẹ gẹgẹ bi awọn angẹli mimọ ti n fo ni aarinmeji ọrun, si eniyan, O fẹ ki gbogbo ẹni ti o ba ni agbara lati ronu o tẹti silẹ si iṣẹ iranṣẹ naa. Idajọ ti o banilẹru ti a ṣe fun jijọsin ẹranko naa ati aworan rẹ (Ifihan 14:9—11), yẹ ki o mu gbogbo eniyan o fi tọkantọkan kẹkọ asọtẹlẹ lati mọ ohun ti ami ẹranko naa jẹ, ati bi wọn ko ṣe ni gba a. Ṣugbọn ọgọọrọ awọn eniyan yi eti wọn kuro ninu gbigbọ otitọ, wọn si yi si itan arosọ. Apostoli Pọlu sọ ni wiwo ọjọ ikẹyin wipe: “Akoko yoo wa nigba ti wọn ko nile farada ẹkọ ti o ye kooro.” 2 Timoti 4:3. Akoko naa ti de ni kikun. Awọn eniyan ko fẹ otito Bibeli, nitori pe o di ifẹ ọkan ẹṣẹ ti o fẹran aye lọwọ, Satani si fun wọn ni ẹtan ti wọn n fẹ.

Ṣugbọn Ọlọrun yoo ni awọn eniyan lori ilẹ aye lati fiyesi Bibeli, ani Bibeli nikan ṣoṣo, gẹgẹ bi odiwọn ẹkọ ati ipilẹ gbogbo iṣẹ atunṣe. Ero awọn ọmọwe, ironu imọ sayẹnsi, igbagbọ tabi aṣẹ igbimọ ẹsin, bi wọn ti pọ to, ti wọn si tako ara wọn bi ijọ ti wọn duro fun, ohùn ọpọ eniyan—ki i ṣe ọkan tabi gbogbo awọn wọnyi ni a gbọdọ wo gẹgẹ bi ẹri fun tabi lati tako igbagbọ ẹsin. Ki a to gba igbagbọ tabi ilana kan, a nilati beere “Bayi ni Oluwa wi” lọna ti o han kedere lati ti i lẹyin.

Satani n ṣe akitiyan nigba gbogbo lati jẹki a fiye si eniyan dipo Ọlọrun. O n dari eniyan lati wo awọn bisọbu, alufa, olukọni nipa Ọlọrun, gẹgẹ bi oludari wọn dipo ki wọn wa Iwe Mimọ lati kọ nipa ojuṣe wọn funra wọn. Nipa ṣiṣe akoso iye awọn olori wọnyi, o le dari ọpọlọpọ eniyan gẹgẹ bi ifẹ rẹ.

Nigba ti Kristi wa lati sọ ọrọ iye, awọn eniyan lasan fi tayọtayọ gbọ ọrọ Rẹ; ọpọ, ani awọn alufa ati awọn alaṣẹ gbagbọ ninu Rẹ. Ṣugbọn awọn agba ninu iṣẹ alufa ati awọn alagbara ni orilẹ ede naa pinu lati da lẹbi ati lati kọ lati gba ikọni Rẹ. Bi o tilẹ jẹ wipe lasan ni wọn ṣe ninu gbogbo akitiyan wọn lati ri ẹsun kan ka si lẹsẹ, bi o tilẹ jẹ wipe wọn ni imọlara ipa agbara ọrun ati ọgbọn ti o wa ninu ọrọ Rẹ, sibẹ

wọn ri ara wọn sinu iwa ẹtanu, wọn kọ eri ti o han kedere nipa bi O ti jẹ Mesaya silẹ, ki wọn ma baa di ọmọ ẹyin Rẹ. Awọn alatako Jesu wọnyi jẹ ẹni ti a ti kọ awọn eniyan lati ọmọde wa lati bọwọ fun, wọn n tẹriba fun aṣẹ wọn laibeere ibeere. Wọn beere, "Kilode ti awọn alaṣẹ ati awọn akọwe ko fi gbagbọ ninu Jesu? Ṣe awọn onifọkansin wọnyi ko ni gba a ni bi o ba jẹ wipe Oun ni Kristi naa?" Ipa iru awọn olukọ wọnyi ni o mu ki orilẹ ede Ju o kọ Olurapada wọn silẹ.

Ẹmi ti o jẹ ki awọn alufa ati awọn alaṣẹ se ohun ti wọn ṣe ni ọpọlọpọ ti wọn sọ wipe wọn jẹ olufọkansin loni n fihan. Wọn kọ lati ṣe ayẹwo ẹri Iwe Mimọ nipa otitọ pataki fun akoko yii. Wọn tọka si iye wọn, ọrọ wọn ati okiki wọn, wọn wa n fi oju abuku wo awọn ti wọn n kede otitọ gẹgẹ bi awọn eniyan perete, otoṣi, ti ko lokiki, ti wọn ni igbagbọ ti o ya wọn sọtọ si araye.

Kristi ri wipe ipo aṣẹ ti ko bojumu ti awọn akọwe ati Farisi duro si, ko ni parẹ nigba ti a ba fọn awọn Ju ka. O ni iwoye isọtẹlẹ nipa iṣe gbigbe aṣẹ eniyan ga lati ṣe akoso ẹri ọkan, eyi ti o jẹ egun fun ijọ lati igba yii wa. Ibawi ẹlẹru Rẹ si awọn akọwe ati Farisi, ati ikilo Rẹ si awọn eniyan lati maṣe tẹle awọn adari afọju wọnyi, ni a kọ silẹ gẹgẹ bi ikilọ fun awọn iran ti n bọ.

Ijọ Romu fun awọn alufa nikanṣoṣo ni aṣẹ lati ṣe itumọ Iwe Mimọ. Nigba ti a ba sọ wipe awọn alufa nikan ni wọn kun oju oṣuwọn lati tumọ ọrọ Ọlọrun, o tumọ si wipe a pa a mọ kuro ni ọdọ awọn eniyan. Bi o tilẹ jẹ wipe iṣẹ Atunṣe fi Iwe Mimọ fun gbogbo eniyan, sibẹ agbekalẹ kan naa ti Romu lo di ọpọ eniyan ninu awọn ijọ Protestant lọwọ lati wa Bibeli funra wọn. A kọ wọn lati gba ikọni rẹ bi ijọ ba ṣe tumọ rẹ ti ọpọlọpọ si wa ti wọn ko gbọdọ gba ohunkohun bi o ti wu ki a ṣe fihan kedere ninu Iwe Mimọ to, bi o ba tako igbagbọ wọn, tabi ikọni ti a fi idi rẹ mulẹ ninu ijọ wọn.

Bi o tilẹ jẹ wipe Bibeli kun fun ikilọ fun awọn ẹlẹkọ eke, ọpọlọpọ ni wọn ṣetan lati jọwọ ọkan wọn si ọwọ alufa wọn. Ọpọ awọn olukọ nipa ẹsin loni wa ti ko le sọ idi miran fun ohun ti wọn gbagbọ ju eyi ti awọn adari ẹsin wọn kọ wọn lọ. Wọn re ikọni Olugbala kọja laifiyesi, wọn si gbẹkẹle ọrọ awọn alufa wọn patapata. Ṣugbọn ṣe awọn alufa ko le baku ni? Bawo ni a ṣe le fi ọkan wa si abẹ idari wọn ayafi bi a ba mọ lati inu ọrọ Ọlọrun wipe wọn n tan imọlẹ? Aini okun inú laarin ọpọ eniyan lati yago kuro ninu ọna didan aye ni o n mu ki ọpọlọpọ o maa tẹle iṣisẹ awọn amoye; nipasẹ ilọra wọn lati ṣe ayẹwo funra wọn, a n de wọn mọ ẹwọn itanjẹ pẹlu ainireti. Wọn ri wipe a fi otitọ nipa akoko yii han kedere ninu Bibeli, wọn si ri wipe agbara Ẹmi Mimọ wa pẹlu ikede rẹ, sibẹ, wọn jẹki atako awọn alufa o yi wọn kuro ninu imọlẹ. Bi o tilẹ jẹ wipe ọpọlọ ati ẹri ọkan wọn gbagbọ, awọn ọkan ti a tanjẹ

wọnyi ko gbọdọ ronu yatọ si alufa wọn, wọn jọwọ ero inu ara wọn, ifẹ iye ainipẹkun wọn silẹ fun aigbagbọ, igberaga ati ẹtanu ẹlomiran.

Ọpọlọpọ ọna ni Satani n gba ṣiṣẹ nipasẹ eniyan lati muni nigbekun. O ko ọpọlọpọ si ọdọ ara rẹ nipa siso ifẹ wọn pọ mọ awọn ti wọn jẹ ọta agbelebu Kristi. Ohunkohun ti isopọ yii i baa jẹ, o le jẹ ti obi, idile, igbeyawo, tabi ojulumọ, iṣẹ kan naa ni wọn n ṣe; awọn ti wọn n tako otitọ n lo agbara wọn lati dari ẹri ọkan, ti ọkan ti o wa ni abẹ iṣakoso wọn ko ni agbara ti o to tabi ominira lati ṣe igbọran si ẹri ọkan ara wọn.

Otitọ ati ogo Ọlọrun ko ṣe e ya nipa, ko ṣe e ṣe fun wa pẹlu Bibeli ni arọwọto wa, lati bọwọ fun Ọlọrun pẹlu ero ti ko tọ. Ọpọlọpọ ni wọn sọ wipe ohun ti eniyan gbagbọ ko ṣe pataki, bi o ba ti gbe igbesi aye ti o dara. Ṣugbọn igbagbọ ni o n dari igbesi aye eniyan. Bi imọlẹ ati otitọ ba wa ni arọwọto wa, ti a si kọ lati lo anfani lati gbọ ati lati ri, o tumọ si wipe a kọ ọ silẹ niyẹn; a n yan okunkun ju imọlẹ lọ.

"Ọna kan wa ti o dara loju eniyan, ṣugbon opin rẹ jẹ ọna iku." Owe 16:25. Aimọkan ki i ṣe awawi fun ẹṣẹ tabi aṣiṣe nigba ti a ni gbogbo anfani lati mọ ifẹ Ọlọrun. Ọkunrin kan n rinrin ajo, o de ibi ti orisirisi oju ọna wa, ti patako-ajuwe si sọ ibi ti gbogbo wọn yoo yọri si. Bi ko ba gba ti patako-ajuwe, ti o si gba oju ọna yoowu ti o ba ro wipe o tọna, o le ṣe e tọkantọkan, ṣugbọn nikẹyin a ba ara rẹ ni oju ọna ti ko tọ.

Ọlọrun ti fun wa ni ọrọ Rẹ ki a le mọ awọn ikọni rẹ, ki a si mọ funra wa ohun ti O n beere lọwọ wa. Nigba ti amofin naa wa si ọdọ Jesu pẹlu ibeere, "Kini ki emi o ṣe lati le jogun iye ainipẹkun?" Olugbala da pada sinu Iwe Mimọ, O wipe: "Kini a kọ sinu ofin? Kini o ti wi?" Aimọkan ko ni jẹ awawi fun ọmọde tabi agba, bẹẹ ni ko ni yọ wọn kuro ninu ijiya ti o yẹ fun riru ofin Ọlọrun nitori agbekalẹ tootọ ofin naa ati ilana ati ojuṣe wọn ti wa lọwọ wọn. Kò tó lati ni erongba rere, ko to lati ṣe ohun ti eniyan ro wipe o tọna tabi ohun ti alufa sọ wipe o dara. Igbala ọkan rẹ ni a n sọrọ le lori, o si nilati wa Iwe Mimọ funra rẹ. Ko si bi igbagbọ ọkan rẹ ti le lagbara to, ko si bi o ti le ni igboya wipe alufa naa mọ otitọ to, eyi ki i ṣe ipilẹ rẹ. O ni aworan ti o n tọka si gbogbo oju ọna ninu irin ajo lọ si ọrun, ko si yẹ ki o ṣe àbùsọ ohun kankan.

O jẹ ojuṣe akọkọ ati eyi ti o ga julọ fun gbogbo ẹni ti n ronu lati kọ lati inu Iwe Mimọ ohun ti i ṣe otitọ, ki o wa maa rin ninu imọlẹ ki o si gba awọn miran niyanju lati tẹle apẹẹrẹ oun. Ni ojoojumọ ni o yẹ ki a maa fi tọkantọkan kẹkọ Bibeli, ki a maa yẹ gbogbo ero wo ki a si maa fi ẹṣẹ we ẹṣẹ. Pẹlu iranlọwọ Ọlọrun a nilati ni igbagbọ wa funra wa nitori ti a o jiyin niwaju Ọlọrun funra wa ni.

Awọn otitọ ti a fihan kedere ninu Bibeli ni awọn ọmọwe ti fi sinu iyemeji pẹlu afarawe ọgbọn nla ti wọn n kọni wipe Iwe Mimọ ni itumọ ikọkọ, itumọ aṣiri ni ọna ẹmi ti ko farahan daradara ninu ede ti a lo. Iru awọn eniyan wọnyi ni Jesu sọ fun wipe: "Ẹyin ko mọ Iwe Mimọ, tabi agbara Ọlọrun." Maku 12:24. A nilati ṣe alaye ọrọ Bibeli gẹgẹ bi itumọ rẹ gan an, ayafi bi a ba lo ami tabi akajuwe. Kristi ti ṣe ileri funni: "Bi ẹnikẹni yoo ba ṣe ifẹ Rẹ, yoo mọ nipa ikọni naa." Johanu 7:17. Bi awọn eniyan yoo ba gba Bibeli bi o ti wi, bi ko ba si awọn ẹlẹkọ eke lati ṣi awọn eniyan lọna ati lati dabaru iyè wọn, a ba ṣe iṣẹ ti yoo mu inu angẹli dun, ti yoo si mu ọpọ eniyan ti wọn n rare kiri ninu eke wa sinu agbo Kristi.

A nilati lo gbogbo agbara inu wa ninu ikẹkọ Iwe Mimọ a si ni lati lo oye wa ni bi eniyan ti le lo o lati mọ awọn ohun ijinlẹ Ọlọrun sibẹ a ko gbọdọ gbagbe wipe igbọran ati irẹlẹ ọmọde ni ẹmi tootọ ti o yẹ fun akẹkọ. A ko le ni oye awọn ohun ti wọn nira ninu Iwe Mimọ ni ọna kan naa ti a n gba dahun si iṣoro ero ijinlẹ. A ko gbọdọ kẹkọ Bibeli pẹlu igbẹkẹle ara ẹni eyi ti ọpọlọpọ fi n kọ ẹkọ imọ sayẹnsi, bikoṣe pẹlu igbẹkẹle Ọlọrun pẹlu adura ati ifẹ tootọ lati kọ nipa ifẹ Rẹ. A nilati wá pẹlu ẹmi irẹlẹ ti o ṣe e kọ lati gba imọ ni ọdọ EMI NI nla. Lalaiṣe bẹẹ, awọn angẹli buburu a fi ọwọ ba wa niye, wọn a si sé ọkan wa le debi pe otitọ ko ni wọ ọkan wa.

Ọpọlọpọ abala Iwe Mimọ ti awọn ọmọwe pe ni ohun ijinlẹ, tabi ti wọn fo kọja gẹgẹ bi ohun ti ko ṣe pataki, ni wọn kun fun itunu ati ikilọ fun ẹni ti a kọ ni ile ẹkọ Kristi. Idi kan ti ọpọlọpọ awọn ti wọn n kẹkọ nipa Ọlọrun ko ṣe ni oye ti o ye kooro nipa ọrọ Ọlọrun ni wipe wọn di oju wọn si otitọ ti wọn ko fẹ ṣe. Oye otitọ Bibeli ko duro pupọ lori agbara oye ti a fi kọ ọ bikoṣe ọkan kan ati ifẹ tootọ fun ododo.

A ko gbọdọ kẹkọ Bibeli laigbadura. Ẹmi Mimọ nikan ni O le mu ki a mọ iwulo awọn ohun ti o le tete yeni, tabi lati maṣe jẹki a lọ otitọ ti o nira lati yeni lọrun. O jẹ ojuṣe awọn angẹli ọrun lati pese ọkan silẹ lati le ni oye ọrọ Ọlọrun, ti ẹwa rẹ a fi wu wa, ti a o fi gba ikilọ lati inu ikilọ rẹ, ti a o fi ni okun ati agbara lati inu awọn ileri rẹ. A nilati jẹ ki ẹbẹ Onisaamu o jẹ ti wa: "Iwọ ṣi mi ni oju, ki n le ri awọn ohun iyanu lati inu ofin Rẹ." O. Dafidi 119:18. Idanwo saba maa n dabi eyi ti a ko le bori nitori pe a kọ adura ati ẹkọ Bibeli silẹ, ẹni ti a n danwo ko le tete ranti awọn ileri Ọlọrun ki o si fi awọn ohun ija Iwe Mimọ pade Satani. Ṣugbọn awọn angẹli yi awọn ti wọn ṣetan lati gba ẹkọ ninu awọn ohun Ọlọrun ka; ni akoko ti wọn ba si nilo rẹ julọ wọn a mu awọn otitọ ti wọn nilo wa si iranti wọn. Nitori naa "nigba ti ọta ba wa bi igbi omi, Ẹmi Oluwa a gbe ọpagun dide si." Aisaya 59:19.

Jesu ṣe ileri fun awọn ọmọ ẹyin Rẹ: “Olutunu naa, eyi ti i ṣe Ẹmi Mimọ, ẹni ti Baba yoo ran ni orukọ Mi, yoo kọ yin ni ohun gbogbo, yoo si mu ohun gbogbo ti Mo ti sọ wa si iranti yin.” Johanu 14:26. Ṣugbọn a nilati kọkọ ko awọn ikọni Kristi sinu iyè na ki Ẹmi Ọlọrun to le mu wa si iranti wa ni akoko ewu. Dafidi sọ pe, “Ọrọ Rẹ ni mo pa mọ si aya mi, ki n ma baa ṣẹ si Ọ.” O. Dafidi 119:11.

Gbogbo awọn ti ohun iye ainipẹkun wọn ba ni itumo si wọn nilati ṣọra ki iyemeji ma baa wọle. Wọn a kọlu òpó otitọ funra rẹ. Ko ṣe e ṣe lati sa fun isọrọ odi si ati ọgbọn ẹwẹ ikọni ẹtan ti o gbalẹ kan ti aigbagbọ ode oni. Satani n mu ki awọn idanwo rẹ o ba gbogbo eniyan mu. O fi ẹfẹ ati ẹgan kọ lu awọn ti ko le kawe, nigba ti o fi idiwọ imọ sayẹnsi ati ironujinlẹ pade awọn ọmọwe, o ṣe gbogbo wọn lati ru ainigbẹkẹle ati ẹgan fun Iwe Mimọ soke. Ani awọn ọdọ ti wọn ko ni iriri pupọ n gbimọ lati ṣe iyemeji nipa ẹkọ ipilẹ ẹsin Kristẹni. Aigbagbọ awọn ọdọ wọnyi bi o ti kere to ni ipa tirẹ. Nipa eyi a n dari ọpọlọpọ lati fi igbagbọ awọn baba wa ṣẹfẹ ti wọn ko si ka Ẹmi oore ọfẹ si. Heberu 10:29. Ọpọlọpọ eniyan ti i ba jẹ iyin fun Ọlọrun ati ibukun fun araye ni ẹmi rirun aigbagbọ ti bajẹ. Gbogbo awọn ti wọn gbẹkẹle ifọnnu ipinu ọgbọn eniyan ti wọn si ro wipe wọn le ṣe alaye ohun ijinlẹ Ọlọrun ki wọn si mọ otitọ laisi iranlọwọ ọgbọn Ọlọrun n fi ara wọn sinu idẹkun Satani.

A n gbe ni akoko ti o lẹru ninu itan aye yii. A ti fẹrẹ bẹrẹ ipinu lori atubọtan awọn ti n gbe inu aye yii. Ọjọ iwaju ara wa ati igbala awọn ọkan miran duro lori ohun ti a n ṣe nisinsinyii. A nilo lati jẹ ki Ẹmi otitọ o dari wa. Gbogbo atẹle Kristi ni wọn nilati beere tọkantọkan wipe: “Oluwa kini O fẹ ki n ṣe?” A nilo lati rẹ ara wa silẹ niwaju Oluwa pẹlu awẹ ati adura, ki a si ronu daradara lori ọrọ Rẹ, paapaa julọ lori awọn iṣẹlẹ idajọ. Ni akoko yii a nilati ni iriri ti o jinlẹ ninu awọn ohun Ọlọrun. A ko ni akoko kan lati fi ṣofo. Awọn iṣẹlẹ ti wọn ṣe pataki n ṣẹlẹ ni ayika wa, ori ilẹ ti Satani ti n rániníyè ni a wa. Ẹ maṣe sun ẹyin aṣọna Ọlọrun, ọta n lugọ ni ayika wa, o ṣetan nigbakugba bi o ba jafara ti o si toogbe, lati bẹ lu ọ, ki o si pa ọ jẹ.

Ọpọlọpọ ni a tanjẹ nipa ipo ti wọn wa nipato niwaju Ọlọrun. Wọn ki ara wọn ku ori ire nitori iwa buburu ti wọn ko wu, wọn si gbagbe lati sọ nipa iwa rere ati iwa pipe ti Ọlọrun fẹ lati ọdọ wọn, ṣugbọn ti wọn baku lati wu. Ko to wipe wọn jẹ igi ninu ọgba Ọlọrun. Wọn nilati ṣe ohun ti O n fẹ nipa siso eso. Yoo beere lọwọ wọn gbogbo ohun rere ti wọn le ṣe nipasẹ oore ọfẹ Rẹ ti n fun wọn lokun, ṣugbọn ti wọn baku lati ṣe. Ninu iwe ọrun a kọ orukọ wọn sibẹ gẹgẹ bi ẹni ti n gbalẹ lasan. Sibẹ ọrọ awọn eniyan bawọnyi ko wa ni ainireti patapata. Pẹlu awọn ti wọn gan aanu Ọlọrun ti wọn tun ṣaata oore ọfẹ Rẹ, ọkan ifẹ

ti o nipamọra si n bẹbẹ. “Nitori naa O sọ pe, Ji dide iwọ ti n sun, ki o si dide kuro ninu oku, Kristi yoo si fun ọ ni imọlẹ. Nitori naa ẹ ri wipe ẹ rin pẹlu ọgbọn, . . . ni rira igba pada, nitori ti awọn ọjọ kun fun ibi.” Efesu 5:14—16.

Nigba ti akoko idanwo ba de, a o fi gbogbo awọn ti wọn fi ọrọ Ọlọrun ṣe odiwọn igbesi aye wọn han. Ni igba ẹrun, ko si iyatọ kan pato laarin igi ti ewe rẹ ki i rẹ ati awọn igi miran, ṣugbọn nigba ti atẹgun igba otutu ba de igi ti ewe rẹ ki i rẹ koni yi pada, nigba ti ewe awọn yoku yoo si rẹ. Bẹẹ gẹgẹ ni onigbagbọ ti ọkan rẹ jẹ eke ko le ṣe e damọ yatọ si Kristẹni tootọ bayii, ṣugbọn akoko naa de bawa tan ti iyatọ a fi ara han. Ẹ jẹki atako o dide, ki igbonaraju ẹsin ati ainifarada o gbajọba, ki a tanna inunibini pada, awọn ọlọkanmeji ati awọn alagabagebe a mìsíwá mìsẹyin, wọn a si kọ igbagbọ silẹ, ṣugbọn Kristẹni tootọ yoo duro gbọin bi apata, igbagbọ rẹ yoo maa lagbara si, ireti rẹ a mọlẹ si ju ti akoko idẹra lọ.

Onisaamu sọ wipe: “Awọn ẹri Rẹ ni ironu mi.” “Mo ni oye nipasẹ awọn ilana Rẹ: nitori naa mo korira gbogbo ọna eke.” O. Dafidi 119:99, 104.

“Ibukun ni fun ẹni naa ti o ri ọgbọn.” “Yoo dabi igi ti a gbin si ipa omi, ti o tan gbongbo rẹ kalẹ nibi odo, ki yoo si mọ nigba ti ooru ba de, ṣugbọn ewe rẹ yoo tutu; ki yoo si ṣe aniyan ni igba ẹrun, bẹẹ ni ki yoo ni ṣiwọ siso eso.” Owe 3:13; Jeremaya 17:8.

38

Ikilọ Ikẹyin

"Mo ri angẹli miran n sọkalẹ wa lati ọrun, ti o ni agbara nla; ilẹ aye si mọlẹ nitori ogo rẹ. O si kigbe ni ohùn rara pẹlu ohun agbara wipe, Babiloni nla ṣubu, o ṣubu, o si ti di ibugbe awọn ẹmi eṣu, ati ile fun gbogbo ẹmi aimọ, ati ààgò fun gbogbo ẹyẹ alaimọ ati eye buburu." "Mo si gbọ ohun miran lati ọrun n wipe, Ẹ jade kuro ninu rẹ ẹyin eniyan Mi, ki ẹ ma baa ṣe alabapin ẹṣẹ rẹ, ki ẹ ma baa ṣiṣe gba arun rẹ." Ifihan 18:1, 2, 4.

Iwe Mimọ tọka si akoko ti a o ṣe atunsọ ipolongo iṣubu Babiloni bi angẹli keji inu Ifihan 14 (ẹṣẹ 8) ti sọ ọ, pẹlu sisọ, ni afikun, awọn iwa ibajẹ ti wọn ti n wọ inu orişirişi awọn ẹgbẹ ti wọn ko ara wọn jọ pọ di Babiloni, lati akoko ti a ti funni ni iṣẹ iranṣẹ akọkọ, ni igba ẹrun 1844. Ipo ẹsin inu aye ti o banilẹru ni a ṣe alaye rẹ nibi. Ni gbogbo igba ti wọn ba kọ otitọ sile, iyè awọn eniyan a maa ṣokunkun si ni, ọkan wọn a tubọ ni agidi si, titi ti wọn a fi fi ẹṣẹ mulẹ ninu orikunkun alaigbagbọ. Ni kikọ ikilọ ti Ọlọrun fifunni silẹ, wọn a tẹsiwaju lati maa tẹ ọkan ninu awọn Ofin Mẹwa loju, titi ti wọn a fi ṣe inunibini si awọn ti wọn ri wipe o jẹ mimọ. A ṣaata Kristi ninu ẹgan ti a ṣe si ọrọ ati awọn eniyan Rẹ. Bi awọn ijọ ti n gba ikọni ibẹmilo, a o mu ikora-ẹni-nijanu ti a fi si ori ọkan ti ko yipada kuro, ijẹwọ ẹsin yoo wa di aṣọ lati bo ẹṣẹ ti o buru julọ mọlẹ. Igbagbọ ninu ifarahan ẹmi şilẹkun silẹ fun ẹmi atannijẹ ati ikọni ẹmi eṣu, nipa eyi a o ri agbara awọn angẹli buburu ninu awọn ijọ.

A sọ nipa Babiloni ni akoko ti a ṣe afihan rẹ ninu asọtẹlẹ yii pe: "Ẹṣẹ rẹ ti ga de ọrun, Ọlọrun si ti ranti awọn aişedeede rẹ." Ifihan 18:5. O ti kun ago ẹbi rẹ, iparun si ti fẹ bọ sori rẹ. Ṣugbọn Ọlọrun si

ni awọn eniyan Rẹ ni Babiloni, ki O to ṣe ibẹwo idajọ Rẹ, a nilati pe awọn olootọ wọnyi sita, ki wọn ma baa ṣe alabapin ẹṣẹ rẹ, ki wọn "ma baa si gba ijiya rẹ." Nitori naa ni a fi ni ẹgbẹ ti a fi angẹli ti o sọkalẹ lati ọrun wa ṣe akajuwe, eyi ti ilẹ aye mọlẹ pẹlu ogo rẹ, ti o n fi ohun rara kigbe nla, ti o n kede awọn ẹṣẹ Babiloni. Ni ifarakora pẹlu iṣẹ iranṣẹ rẹ, a gbọ wipe: "Jade kuro ninu rẹ, ẹyin eniyan Mi." Awọn ikede wọnyi, ní iṣọkan pẹlu iṣẹ iranṣẹ angẹli kẹta, parapọ di ikilọ ti o kẹyin ti a o fun awọn olugbe aye.

Aye yoo wọ inu iṣẹlẹ ti o lẹru. Awọn agbara aye, ni iṣọkan lati ba aṣẹ Ọlọrun jagun yoo paṣẹ ki "gbogbo eniyan, ati kekere ati nla, ọlọrọ ati otoṣi, ominira ati onde" (Ifihan 13:16), o tẹle aṣa ijọ nipa pipa ọjọ isinmi eke mọ. A o jẹ gbogbo awọn ti wọn kọ lati ṣe igbọran niya, nikẹyin a o sọ wipe iku ni o tọ si wọn. Ni idakeji, ofin Ọlọrun ti o paṣẹ ọjọ Isinmi Ẹlẹda funni n beere fun igbọran o si n ṣe ikilọ ibinu Rẹ si gbogbo ẹni ti o ba ru awọn ilana rẹ.

Pẹlu alaye yekeyeke niwaju eniyan, ẹnikẹni ti yoo ba tẹ ofin Ọlọrun loju lati ṣe igbọran si aṣẹ eniyan a gba ami ẹranko naa; ó gba ami igbọran si agbara ti ó yan lati ṣe igbọran si ju Ọlọrun lọ. Ikilọ lati ọrun ni wipe: "Bi ẹnikẹni ba jọsin ẹranko naa ati aworan rẹ, ti o gba ami rẹ siwaju ori rẹ tabi ni ọwọ ọtun rẹ, oun pẹlu yoo mu ninu waini ibinu Ọlọrun ti a tu jade ni aini abula sinu aago ibinu Rẹ." Ifihan 14:9, 10.

Ṣugbọn ko si ẹni ti yoo jiya ibinu Ọlọrun titi ti a o fi tẹ otitọ naa mọ wọn niye ati lọkan, ti wọn yoo si kọ ọ silẹ. Ọpọ wa ti wọn koi ti i ni anfani lati gbọ otitọ pataki fun akoko yii ri. A koi ti i ṣe alaye ojuṣe wọn si ofin kẹrin fun wọn ni bi o ti jẹ gan an. Ẹni ti n wo gbogbo ọkan ti O si n dan gbogbo ero ọkan wo ko ni fi ẹnikẹni ti o ba fẹ lati ni imọ otitọ silẹ, ki a wa tan an jẹ lori ọrọ ijakadi naa. A ko ni pa aṣẹ naa fun awọn eniyan laimọ. Gbogbo eniyan ni yoo ni imọlẹ ti o to lati le fi oye ṣe ipinu rẹ.

Ọjọ Isinmi ni yoo jẹ ohun idanwo nla fun igbọran, nitori ohun ni koko otitọ ti a n jiyan le lori. Nigba ti idanwo ikẹyin yii ba wa si ori eniyan, nigba naa ni a o fa ila idanimọ si aarin awọn ti n sin Ọlọrun ati awọn ti ko sin In. Nigba ti pipa ọjọ isinmi eke mọ yoo wa ni ibamu pẹlu ofin ilu, ni atako si ofin kẹrin yoo jẹ ṣiṣe igbọran si agbara ti o ṣodi si Ọlọrun, pipa ọjọ Isinmi tooto mọ, ni igbọran si ofin Ọlọrun jẹ ẹri igbọran si Ẹlẹda. Nigba ti ẹgbẹ kan, nipa gbigba ami itẹriba fun agbara aye, gba ami ẹranko naa, ikeji nipa yiyan ami igbọran si aṣẹ Ọlọrun gba edidi Ọlọrun.

Titi di akoko yii, a saba maa n ri awọn ti n waasu otitọ iṣẹ iranṣẹ angẹli kẹta gẹgẹ bi awọn ti n ru ibẹru soke lasan. Asọtẹlẹ wọn wipe ainifarada ẹsin yoo gba akoso ni United States, wipe ijọ ati ilu yoo

parapọ lati ṣe inunibini si awọn ti wọn pa ofin Ọlọrun mọ ni a ri gẹgẹ bi eyi ti ko bojumu ti ko si lẹsẹ nilẹ. A ti fi igboya sọ wipe ilẹ yii ko le yatọ si ohun ti o ti n jẹ—oludaabo bo ominira ẹsin. Ṣugbọn bi nipa fifi aṣẹ muni pa ọjọ Sọnde mọ ti n ru soke kaakiri, iṣẹlẹ ti a ṣe iyemeji nipa rẹ fun igba pipẹ ti a ko si gbagbọ ni a n ri ti o n bọ wa, ti iṣẹ iranṣẹ angẹli kẹta yoo si ni ipa ti ko le ni tẹlẹ.

Ni akoko gbogbo Ọlọrun n ran awọn iranṣẹ Rẹ lati ba ẹṣẹ wi ninu aye ati ninu ijọ. Ṣugbọn awọn eniyan fẹran ki a sọrọ didun fun wọn, ko si si aye fun otitọ ailabawọn ti a ko pọn. Opọ awọn alatunṣe, ni ibẹrẹ iṣẹ wọn pinu lati rọra ṣe ni biba ẹṣẹ ijọ ati ti orilẹ ede wi. Wọn n reti lati dari awọn eniyan pada si ikọni Bibeli pẹlu apẹẹrẹ igbe aye mimọ Kristẹni. Ṣugbọn Ẹmi Ọlọrun ba le wọn gẹgẹ bi O ti wá sori Elija, ti O mi si lati ba ẹṣẹ ọba buburu ati ti Isreali apẹyinda wi; wọn ko le ṣiwọ wiwaasu ọrọ ailabawọn ti Bibeli—ikọni ti wọn kọkọ lọra lati waasu. A mu wọn fi itara ṣe ikede otitọ ati ewu ti n wu awọn ọkan. Ọrọ ti Ọlọrun fun wọn ni wọn n sọ laibẹru ohun ti yoo ti ẹyin rẹ wa, a si fi ipa mu awọn eniyan lati gbọ ikilọ.

Bayi ni a o ṣe waasu iṣẹ iransẹ angẹli kẹta. Nigba ti akoko ba to lati fifunni pẹlu agbara nla Oluwa a ṣiṣẹ nipasẹ awọn iranṣẹ onirẹlẹ Rẹ, yoo dari oye awọn ti wọn fi ara wọn jin fun iṣẹ Rẹ. Oṣiṣẹ naa a kun oju oṣuwọn, ki i ṣe pẹlu ẹkọ lati ile ẹkọ giga bikoṣe pẹlu agbara Ẹmi Rẹ. A o rọ awọn eniyan ti wọn kun fun igbagbọ ati adura lati jade lọ pẹlu itara mimọ lati kede ọrọ ti Ọlọrun fifun wọn. A o ṣi ẹṣẹ Babiloni sita kedere. Abayọri ẹlẹru ti fifi aṣẹ ijọba muni pa ilana ijọ mọ, aṣa ibẹmilo ti n wọle bi agbara ijọ padi ti n dagba kiakia ni bonkẹlẹ—gbogbo rẹ ni a o ṣi aṣọ loju wọn. Nipasẹ awọn iṣẹ iranṣẹ ẹlẹru wọnyi awọn eniyan a taji. Ọpọlọpọ awọn eniyan ti koi ti i gbọ iru awọn ọrọ bawọnyi ri ni yoo gbọ. Pẹlu iyanu wọn a gbọ wipe ijọ ni Babiloni naa ti o ṣubu nitori aṣiṣe ati ẹṣẹ rẹ nitori bi o ti ṣe kọ otitọ ti a ran si lati ọrun wa silẹ. Bi awọn eniyan ba ti n lọ si ọdọ awọn olukọ wọn tẹlẹ pẹlu ibeere onitara pe, Ṣe awọn nnkan wọnyi ri bẹẹ? awọn oniwaasu a gbe itan arosọ kalẹ, wọn a sọ asọtẹlẹ ọrọ didun, lati le mu ibẹru wọn kuro ati lati pa ẹri ọkan wọn ti o ji lẹnu mọ. Ṣugbọn nigba ti ọpọlọpọ kọ lati jẹ ki aṣẹ eniyan lasan o tẹ wọn lọrun wọn si beere fun “Bayi ni Oluwa wi,” awọn iṣẹ iranṣẹ ti o lokiki, bi i ti awọn Farisi aye igbaani, ti wọn kun fun ibinu nitori ti a ko gba aṣẹ wọn laibeere ibeere, yoo si sọ wipe iṣẹ iranṣẹ Satani ni wọn a si ru awọn eniyan ti wọn fẹran ẹṣẹ soke lati kẹgan ati lati ṣe inunibini si awọn ti n waasu rẹ.

Bi ariyanjiyan naa ti n wọ awọn ilẹ miran ti a si n dari iye awọn eniyan si ofin Ọlọrun ti a n ru, Satani a ta giri. Agbara ti n tẹle iṣẹ iranṣẹ naa a tubọ mu ki inu o bi awọn ti n tako o si ni. Awọn alufa a lo

agbara ti o fẹrẹ kọja ti eniyan lati ti ilẹkun mọ imọlẹ naa ki o ma baa tan si ori agbo wọn. Pẹlu ohun gbogbo ti o wa ni ikawọ wọn, wọn a ṣe akitiyan lati tẹ ijiroro lori awọn koko ọrọ pataki wọnyi ri. Ijọ a pe ọwọ agbara nla ijọba ninu iṣẹ yii, awọn ateḷe popu ati awọn Protestant a wa ni iṣọkan. Bi ẹgbẹ ti n ṣiṣẹ lati fi ipa muni pa ọjọ Sọnde mọ ti n lo agidi ti wọn si n nigboya si, a yoo ṣe ofin lati tako awọn ti n pa ofin mọ. A o fi sisan owo itanran ati itimọle dẹruba wọn, a o fi ipo agbara lọ awọn miran, a o si fi ẹbun ati anfani lọ awọn miran gẹgẹ bi ituloju lati kọ igbagbọ wọn silẹ. Ṣugbọn idahun iduroṣinṣin wọn ni pe: "Ẹ fi aṣiṣe wa han wa lati inu ọrọ Ọlọrun"—iru ibeere kan naa ti Luther beere labẹ iru iṣẹlẹ kan naa.

Awọn ti a pe lẹjọ si ile ẹjọ a sọrọ alagbara lati jẹri si otitọ, ti awọn ti o gbọ a si pinu lati pa gbogbo ofin Ọlọrun mọ. Bayi ni a o ṣe tan imọlẹ naa si ọpọlọpọ ti i ba ma mọ ohun kan nipa awọn otitọ wọnyi.

A o ṣesi ṣiṣe igbọran tọkantọkan si ọrọ Ọlọrun bi iṣọtẹ. Awọn ti Satani ti fọ loju, obi a wuwa lile ati iwa onroro si ọmọ rẹ ti o jẹ onigbagbọ, ọga lọkunrin ati lobinrin a fiyajẹ ọmọ ọdọ wọn ti n pa ofin mọ. A o dawọ ifẹ duro, a o kọ awọn ọmọ silẹ a o si le wọn kuro ninu ile. Ọrọ Pọlu a wa si imuṣẹ ni bi o ti ṣe kọ ọ: "Gbogbo awọn ti yoo gbe igbesi aye iwabiọlọrun ninu Kristi Jesu yoo jiya inunibini." 2 Timoti 3:12. Bi awọn olugbeja otitọ ti kọ lati bọwọ fun isinmi ọjọ Sọnde, a o ju diẹ lara wọn sinu ọgba ẹwọn, a o le awọn miran kuro ni ilu, a o ṣe awọn miran bi ẹru. Ọgbọn eniyan nisinsinyii ri gbogbo iwọnyi gẹgẹ bi ohun ti ko le ṣẹlẹ, ṣugbọn bi a ba ti n mu ikoninijanu Ẹmi Ọlọrun kuro ni ọdọ awọn eniyan, ti wọn a si wa labẹ iṣakoso Satani, ẹni ti o korira ofin Ọlọrun, awọn iṣẹlẹ ti ko yeni a bẹrẹ. Ọkan le kun fun iwa ika nigba ti a ba mu ifẹ ati ibẹru Ọlọrun kuro.

Bi iji naa ti n bọ, ẹgbẹ nla kan ti wọn jẹwọ igbagbọ ninu iṣẹ iranṣẹ angẹli kẹta, ṣugbọn ti ko ni iyasimimọ nipasẹ igbọran si otitọ, a fi ipo wọn silẹ, wọn a si darapọ mọ awọn ẹgbẹ alatako. Nipa didarapọ mọ aye ati kikopa ninu ẹmi rẹ, wọn n woye ọrọ ninu imọlẹ kan naa, nigba ti idanwo ba si de, wọn ṣetan lati ya si ibi ti o rọrun ti o tun lokiki. Awọn eniyan ti wọn ni ẹbun ti wọn n sọrọ didun, ti wọn fi igba kan ri yọ ninu otitọ, lo agbara wọn lati tan awọn ọkan jẹ ati lati ṣi wọn lọna. Wọn di ọta kikoro si awọn arakunrin wọn tẹlẹ ri. Nigba ti a ba mu awọn ti n pa ọjọ Isinmi mọ wa si ile ẹjọ lati dahun fun igbagbọ wọn, awọn apẹyinda wọnyi a jẹ aṣoju Satani to wulo julọ lati fi wọn han ni ọna ti ko tọ ati lati fẹsun kan wọn, pẹlu iroyin eke ati ẹtan wọn a ru ọkan awọn alaṣe soke lati tako wọn.

Ni akoko inunibini yii a o dan igbagbọ awọn iranṣẹ Oluwa wo. Wọn ti ṣe ikilọ funni pẹlu otitọ, ni wiwo Ọlọrun ati ọrọ Rẹ nikan

ṣoṣo. Ẹmi Ọlọrun mi si wọn lọkan, o si fun wọn lokun lati ṣọrọ. Pẹlu itara mimọ ati imisi Ọlọrun ti o lagbara lori wọn, wọn bẹrẹ iṣẹ wọn laiṣeṣiro ohun ti yoo jẹ atubọtan sisọrọ ti Ọlọrun fifun wọn lati fun awọn eniyan. Wọn ko wo ere aye, bẹẹ ni wọn ko wa lati da orukọ tabi ẹmi wọn si. Sibẹ nigba ti iji atako ati ẹgan ba rọ lu wọn, diẹ ti wọn kun fun ibẹru a ṣetan lati sọ wipe: “Bi o ba jẹ wipe a mọ ibi ti ọrọ wa yoo yọri si ni, a kii bati sọrọ.” Wahala yi wọn ka. Satani si n fi idanwo nla kọlu wọn. O dabi ẹnipe iṣẹ ti wọn bẹrẹ pọ ju agbara wọn lọ. Iparun dẹru ba wọn. Imoriya to n fun wọn lokun ko si mọ, sibẹ wọn ko le pẹyinda. Nigba ti wọn ba mọ ipo ainiranlọwọ wọn, wọn a salọ si ọdọ Ẹni Alagbara fun okun. Wọn ranti pe ọrọ ti wọn sọ ki i ṣe ti wọn bikoṣe ti Ẹni ti o sọ fun wọn lati ṣe ikilọ. Ọlọrun fi otitọ sinu ọkan wọn, wọn ko sile ṣe lati ma kede rẹ.

Iru iriri kan naa ni awọn eniyan Ọlọrun ni latẹyinwa. Wycliffe, Huss, Luther, Tyndale, Baxter, Wesley kọni wipe a nilati fi Bibeli dan gbogbo ikọni wo, wọn si sọ wipe ki a kọ gbogbo ohun ti o ba da lẹbi silẹ. Inunibini dide si awọn eniyan wọnyi pẹlu ibinu ti ko dẹyin, sibẹ wọn ko ṣiwọ lati kede otitọ. Orişirişi akoko ninu itan ijọ ni wọn ni otitọ pataki ti o wa fun iwulo awọn eniyan Ọlọrun ni akoko naa. Gbogbo otitọ tuntun ni wọn duro tako ikorira ati atako, awọn ti a fi imọlẹ bukun fun ri idanwo ati idamu. Oluwa fun awọn eniyan ni otitọ pataki ni akoko pajawiri. Tani o jẹ kọ lati kede rẹ? O paṣẹ fun awọn iranṣẹ Rẹ lati kede ipe aanu ti o kẹyin fun araye. Wọn ko le dakẹ, laiṣe wipe wọn fẹ iparun ọkan wọn. Awọn aṣoju Kristi ko ni ohun kankan ṣe pẹlu ayọrisi. Wọn nilati ṣiṣẹ wọn ki wọn si fi ayọrisi rẹ silẹ pẹlu Ọlọrun.

Bi atako ti n gbona si, iporuuru ọkan tun de ba awọn iranṣẹ Ọlọrun, nitori wọn ri bi ẹnipe awọn ni wọn mu wahala wa. Ṣugbọn ẹri ọkan ati ọrọ Ọlọrun fi da wọn loju wipe wọn n ṣe ohun ti o tọ, bi o tilẹ jẹ wipe idanwo naa tẹsiwaju, a fun wọn ni okun lati farada a. Wahala naa n sunmọ wọn si, o si n lagbara si, ṣugbọn igbagbọ ati igboya wọn a dọgba pẹlu akoko pajawiri naa. Ẹri wọn ni: “A ko gbọdọ tọwọ bọ ọrọ Ọlọrun ni ọna ti ko yẹ, ni pinpin ofin Rẹ si meji, ni pipe abala kan ni eyi ti o ṣe pataki ati abala keji wipe ko ṣe pataki, lati le ri oju rere aye. Oluwa wa ti awa n sin le gba wa. Kristi ti ṣẹgun agbara aye ṣe o wa yẹ ki a bẹru aye ti a ti ṣẹgun naa bi?”

Inunibini ní orişirişi ọna jẹ idagbasoke ti yoo wa niwọn igba ti Satani ba si wa, ti ẹsin Kristẹni ba si ni agbara ti o wa laaye. Ko si ẹni ti o le sin Ọlọrun laipe atako ẹgbẹ ogun okunkun si ara rẹ. Awọn angẹli buburu yoo doju kọ ọ pẹlu ibẹru wipe ipa rẹ n mu awọn ti wọn mu ni igbekun kuro lọwọ wọn. Awọn ẹni ibi ti apẹẹrẹ rẹ jẹ ibawi

fun a darapọ mọ wọn lati pin niya pẹlu Ọlọrun nipasẹ idanwo to n fanimọra. Nigba ti awọn wọnyi ko ba ṣe aṣeyọri a a wa lo agbara ipa lati dari ẹri ọkan.

Ṣugbọn niwọn igba ti Jesu ba ṣi jẹ alagbawi eniyan ninu ibi mimọ loke, awọn alaṣẹ ati eniyan a ṣi ni imọlara agbara ikoninijanu Ẹmi Mimọ. O ṣi n ṣe akoso ofin ilẹ naa diẹdiẹ. Bi ki i ba n ṣe nitori awọn ofin wọnyi ni, ipo aye i ba buru ju bi o ti wa nisinsinyii lọ. Nigba ti ọpọ awọn alaṣẹ wa jẹ aṣoju ti n ṣe akikanju fun Satani, Ọlọrun pẹlu ni awọn aṣoju Rẹ laarin awọn adari orilẹ ede. Ọta n mi si awọn iranṣẹ rẹ lati ṣe ofin ti yoo di iṣẹ Ọlọrun lọwọ jọjọ, ṣugbọn awọn angẹli mimọ a mi si awọn adari ilu ti wọn bẹru Oluwa lati tako iru ofin bẹẹ pẹlu ọrọ ti wọn ko ni le fesi si. Awọn eniyan perete ni yoo da ìṣàn iwa buburu nla duro. A o da atako awọn ọta otitọ duro ki iṣẹ iranṣẹ angẹli kẹta baa le ṣe iṣẹ rẹ. Nigba ti a ba ṣe ikilọ ti o kẹyin funni, awọn adari ti Oluwa n tipasẹ wọn ṣiṣẹ bayi a fiye si, diẹ lara wọn a si gba a, wọn a si duro pẹlu awọn eniyan Ọlọrun ni akoko idamu.

Angẹli ti o darapọ mọ ikede iṣẹ iranṣẹ angẹli kẹta yoo tan imọlẹ si gbogbo aye pẹlu ogo rẹ. Iṣẹ ti yoo tan kaakiri gbogbo aye ati agbara ti a ko riri ni a n sọtẹlẹ nibi. Ẹgbẹ onireti ti 1840—44 jẹ ifarahan agbara Ọlọrun lọna ti o logo, a gbe iṣẹ iranṣẹ angẹli akọkọ de gbogbo ibudo ajiyinrere ninu aye, ati ni awọn orilẹ ede miran, a ri ifẹ si ọrọ ẹsin ti a ri keyin lati igba iṣẹ Atunṣe ni ọrundun kẹrindinlogun; ṣugbọn ẹgbẹ alagbara yii a ju awọn wọnyi lọ labẹ ikilọ ti o kẹyin ti angẹli kẹta.

Iṣẹ naa yoo fi ara jọ ti ọjọ Pẹntikọsti. Bi a ti funni ni "ojo akọrọ," ni titu Ẹmi Mimọ sita ni ibẹrẹ iyinrere lati le jẹ ki eso ti o ṣeyebiye o wu, bẹẹ gẹgẹ ni a o funni ni "ojo arọkuro" ni opin rẹ lati le mu ki ikore o pọn. "Nigba naa ni a o mọ, bi a ba tẹsiwaju lati mọ Oluwa: a ti pèsè ijade lọ Rẹ bi owurọ; yoo si wa si ọdọ wa bi ojo, bi ojo arọkuro ati ojo akọrọ sori ilẹ aye." Hosea 6:3. "Nitori naa ẹ yọ, ẹyin ọmọ Sioni, ki ẹ si ni inu didun ninu Oluwa yin: nitori ti O ti fun yin ni ojo akọrọ ni bi o ti yẹ, yoo si jẹ ki ojo o rọ sori yin, ojo akọrọ ati ojo arọkuro." Joẹli 2:23. "Ni ọjọ ikẹyin ni Ọlọrun wi, Emi yoo tu Ẹmi Mi si ori gbogbo ẹran ara." "Yoo si ṣe, ẹnikẹni ti o ba kepe orukọ Oluwa ni a o gbala." Iṣe 2:17, 21.

Iṣẹ nla iyinrere ki yoo pari laisi ifarahan agbara Ọlọrun bi eyi ti o farahan ni ibẹrẹ rẹ. Awọn asọtẹlẹ ti wọn wa si imuṣẹ ninu itujade ojo akọrọ ni ibẹrẹ iyinrere yoo wa si imuṣẹ lẹẹkansi ninu ojo arọkuro ni igba opin rẹ. Akoko yii ni "akoko itura" eyi ti apostoli Peteru wo ọjọ iwaju fun nigba ti o sọ wipe: "Ẹ ronupiwada nitori naa, ki ẹ si yipada, ki a le mu ẹṣẹ yin kuro, nigba ti akoko itura yoo de lati iwaju Oluwa; yoo si ran Jesu wa." Iṣe 3:19, 20.

Awọn iranṣẹ Ọlọrun, pẹlu oju wọn ti o mọlẹ ti o si n tan pẹlu iyasọtọ mimọ yoo yara kankan lati ibikan lọ si ekeji lati kede iṣẹ iranṣẹ lati ọrun. Pẹlu ọpọlọpọ ohùn kaakiri ilẹ aye, a o funni ni ikilọ naa. A o ṣe iṣẹ iyanu, a o mu awọn alaisan larada, iṣẹ ami ati iṣẹ iyanu yoo tẹle awọn onigbagbọ. Satani pẹlu a ṣiṣẹ pẹlu iṣẹ iyanu eke, ani yoo mu ina sọkalẹ lati ọrun wa niwaju eniyan. Ifihan 13:13. Nipa eyi, a o mu ki awọn olugbe aye o ṣe ipinu wọn.

A yoo jiyin iṣẹ iranṣẹ naa, ki i ṣe pẹlu ọrọ eniyan bikoṣe pẹlu igbagbọ jijinlẹ ti Ẹmi Ọlọrun. A ti ṣe alaye ọrọ naa. A ti funrungbin eso naa, bayii yoo wu, yoo si so eso. Iwe atẹjade ti awọn ajiyinrere pin kaakiri ni ipa ti wọn, sibẹ ọpọlọpọ ti a fọwọba lọkan ni a ko gba laaye lati ni oye otitọ naa ni kikun tabi lati ṣe igbọran si. Nisinsinyii, itansan imọlẹ n tan si ibi gbogbo, a si n ri otitọ bi o ti n fi ara han ketekete, awọn ọmọ Ọlọrun ti wọn jẹ olootọ ọkan si n ja ide ti o de wọn. Ibaṣepọ ti idile, ibaṣepọ ti ijọ ko lagbara lati da wọn duro mọ. Otitọ ṣeyebiye ju ohun gbogbo lọ. Laika awọn agbara ti wọn parapọ tako otitọ si, ọpọlọpọ ni wọn duro si ọdọ Ọlọrun.

39

Akoko Idamu

"Nigba naa ni Maikẹli yoo dide, Ọmọ Alade nla ti n dide fun awọn ọmọ eniyan rẹ: akoko idamu yoo si wa, iru eyi ti koi ti i wa ri lati igba ti orilẹ ede ti wa ani titi di akoko naa: ni akoko naa ni a o gba awọn eniyan Rẹ la, gbogbo awọn ti a kọ orukọ wọn sinu iwe." Danieli 12:1.

Nigba ti iṣẹ iranṣẹ angẹli kẹta ba pari, aanu ko ni bẹbẹ fun awọn ẹlẹṣẹ ti n gbe inu aye mọ. Awọn eniyan Ọlọrun a ti pari iṣẹ wọn. Wọn ti gba "ojo arọkuro," "itura lati iwaju Oluwa wa," a si ti pese wọn silẹ fun akoko wahala to wa niwaju wọn. Awọn angẹli n yara lọ wọn si n bọ ni ọrun. Angẹli kan to n ti inu aye bọ ṣe ikede wipe iṣẹ naa ti pari; a ti ṣe idanwo ti o kẹyin fun araye, gbogbo awọn ti wọn fi ara wọn han gẹgẹ bi olootọ si ilana Ọlọrun si ti gba "edidi Ọlọrun alaaye." Nigba naa ni Jesu dawọ iṣẹ ibalaja Rẹ ni ibi mimọ loke duro. O gbe ọwọ Rẹ soke, pẹlu ohun nla, O sọ pe, "O pari," gbogbo ẹgbẹgun awọn angẹli si fi ade wọn lelẹ bi O ti n ṣe ikede ẹlẹru ni wipe: "Ẹni ti n ṣe alaisootọ, jẹ ki o maa ṣe alaisootọ nisọ: ati ẹni ti n ṣe alaimọ, jẹ ki o maa ṣe alaimọ nisọ: ati ẹni ti n ṣe olododo jẹ ki o maa ṣe olododo nisọ: ati ẹni ti o jẹ mimọ, jẹ ki o maa jẹ mimọ nisọ." Ifihan 22:11. A ti ṣe ipinu lori gbogbo ẹjọ boya fun iku tabi fun iye. Kristi ti ṣe iwẹnumọ fun awọn eniyan Rẹ, O si ti pa ẹṣẹ wọn rẹ. Iye awọn ọmọ ijọba Rẹ ti pe; a ti fẹ fi "ijọba ati agbara ijọba naa, ati titobi ijọba naa labẹ gbogbo ọrun," fun awọn ajogun igbala, Jesu yoo si ṣe akoso bi Ọba awọn ọba ati Oluwa awọn oluwa.

Nigba ti O ba kuro ni ibi mimọ, okunkun a ṣubo awọn olugbe aye. Ni akoko ẹlẹru naa awọn olododo nilati gbe niwaju Ọlọrun mimọ laisi

olubalaja. A ti mu ijanu ti o wa lori awọn eniyan buburu kuro, Satani si ni akoso patapata lori awọn ti ko ronupiwada nikẹyin. Ipamọra Ọlọrun ti pari. Aye ti kọ aanu Rẹ silẹ, wọn ti kẹgan ifẹ Rẹ, wọn si ti tẹ ofin Rẹ loju. Awọn ẹni ibi ti kọja aala oore ọfẹ wọn, lẹyinọreyin o mu Ẹmi Ọlọrun, ti wọn n fi gbogbo igba kọ silẹ, kuro. Laini aabo oore ọfẹ Ọlọrun, wọn ko ni aabo kuro lọwọ eṣu. Ni akoko naa Satani a ti awọn olugbe aye sinu rogbodiyan nla ti o kẹyin. Bi awọn angẹli Ọlọrun ti ṣiwọ lati ṣe idena fun ẹfufu lile ibinu eniyan, gbogbo awọn agbára omi, ina, ati ti ilẹ ni a o tu silẹ. Gbogbo aye ni yoo kun fun iparun ti o lẹru ju eyi ti o wa si ori Jerusalẹmu igbaa ni lọ.

Angẹli kan ṣoṣo ni o pa gbogbo akọbi awọn ara Ijibiti ti o si fi ọfọ kun ilẹ naa. Nigba ti Dafidi ṣẹ si Ọlọrun nipa kika awọn eniyan, angẹli kan ni o fa iparun nla ti a fi ṣe ijiya ẹṣẹ naa. Iru agbara iparun kan naa ti awọn angẹli mimọ lo nigba ti Ọlọrun paṣẹ ni awọn angẹli buburu a lo nigba ti O ba faaye gba a. Awọn agbara wà ti wọn ti ṣetan wọn tilẹ n duro de ifaye gba Ọlọrun lasan ni lati le tan iparun kalẹ si ibi gbogbo.

A ti fi ẹsun kan awọn ti wọn bọwọ fun ofin Ọlọrun wipe awọn ni wọn n mu idajọ wa sori aye, a o ri wọn bi okunfa rogbodiyan ẹlẹru ninu aye, ija ati itajẹsilẹ laarin awọn ti wọn n fi iparun kun inu aye. Agbara ti o tẹle ikilọ ikẹyin bi awọn eniyan buburu ninu, ibinu wọn ru si gbogbo awọn ti wọn gba iṣẹ iranṣẹ naa, yoo si ru ẹmi ikorira ati inunibini soke de gongo.

Nigba ti Ọlọrun kuro laarin awọn orilẹ ede Ju, awọn alufa ati awọn eniyan ko mọ. Bi o tilẹ jẹ wipe wọn wa labẹ akoso Satani, ti ibinu nla ti o buru julọ si n dari wọn, wọn ṣi ri ara wọn bi ayanfẹ Ọlọrun. Iṣẹ iranṣẹ inu tẹmpili n tẹsiwaju, a n ṣe irubọ lori pẹpẹ ti a ti sọ di eeri, lojoojumọ ni a n ṣe ibukun Ọlọrun sori awọn eniyan ti wọn jẹbi ẹjẹ Ọmọ ti Ọlọrun fẹran ti wọn si n wa lati pa awọn oniwaasu ati apostoli Rẹ. Bẹẹ gẹgẹ nigba ti a ba ṣe idajọ ti ko ṣe e yipada ninu ibi mimọ, ti a si ti ṣe ipinu atubọtan aye yii laileyipada, awọn olugbe aye yii ko ni mọ. Awọn ti a ti gba Ẹmi Ọlọrun kuro lọdọ wọn lẹyinọrẹyin a si tẹsiwaju lati maa tẹle ilana ẹsin, ti itara bii ti Satani eyi ti ọmọ alade iwa buburu a fi kun wọn lati ṣe ete ika rẹ yoo farajọ itara fun Ọlọrun.

Bi ọjọ Isinmi ti jẹ koko ọrọ pataki fun ariyanjiyan kaakiri inu ẹsin Kristẹni, ti awọn alaṣẹ ẹsin ati ti ilu si ti parapọ lati ṣe ofin lati pa ọjọ Sọnde mọ, kikọ ti iwọnba awọn eniyan perete kọ jalẹ lati ṣe ohun ti gbogbo awọn eniyan beere fun yoo mu ki wọn di ẹni ifibu loju gbogbo aye. A o sọ wipe a ko gbọdọ faaye gba awọn ti wọn duro lati tako agbekalẹ ijọ ati ofin ilu, wipe o dara fun wọn lati jiya ju ki a ju gbogbo awọn orilẹ ede sinu rogbodiyan ati iwa ailofin lọ. Bakan naa

ni “awọn adari awọn eniyan” ṣe sọrọ nipa Kristi ni ẹgbẹsan (1800) ọdun seyin. Alarekereke Kaifa wipe, “O san fun wa ki ẹnikan o ku fun awọn eniyan ki gbogbo orilẹ ede ma baa ṣegbe.” Johanu 11:50. Yoo dabi ẹnipe iṣọwọsọrọ yii peye, nikẹyin a o ṣe ofin lati lodi si awọn ti wọn ya ọjọ Isinmi si mimọ, a o da wọn lẹbi gẹgẹ bi awọn to yẹ fun ijiya ti o buru julọ, a o si fun awọn eniyan ni ominira, lẹyin akoko kan lati pa wọn. Ẹsin Romu ni Europe ati ẹsin Protestant ti o ti yan apẹyinda ni Amẹrika yoo ṣe ohun kan naa si awọn ti wọn bu ọla fun ilana Ọlọrun.

Awọn eniyan Ọlọrun a wa bọ sinu wahala ati iporuuru ọkan ti woli naa pe ni akoko idamu Jakọbu. “Bayi ni Oluwa wi: A ti gbọ ohùn iwariri, ti ibẹru, ki i si i ṣe ti alaafia. . . . Gbogbo oju joro. O maṣe o! nitori ti ọjọ naa tobi, ti o fi jẹ wipe ko si eyi ti o dabi rẹ: ani akoko idamu Jakọbu ni; ṣugbọn a o gba a la kuro ninu rẹ.” Jeremaya 30:5—7.

Aṣalẹ iporuuru Jakọbu, nigba ti o jijakadi ninu adura fun idasilẹ kuro lọwọ Esau (Jẹnẹsisi 32:24—30) ṣe afihan iriri awọn eniyan Ọlọrun ni akoko idamu. Nitori eke ti o ṣe lati gba ibukun ti baba rẹ fẹ ṣe fun Esau, Jakobu sa asala fun ẹmi rẹ nigba ti bi arakunrin rẹ ti n leri iku dẹru ba a. Lẹyin ti o wa ni ilẹ ajeji fun ọpọlọpọ ọdun, o jade pẹlu aṣẹ Ọlọrun lati pada si ilẹ abinibi rẹ pẹlu awọn iyawo ati awọn ọmọ rẹ ati agbo ẹran rẹ. Nigba ti o de ibode ilẹ naa, ẹru baa pẹlu iroyin wipe Esau n bọ wa pẹlu ẹgbẹ awọn jagunjagun, laiṣiyemeji o n bọwa gbẹsan ni. Awọn ẹgbẹ Jakọbu lainihamọra, lailaabo, dabi ẹni pe wọn fẹ ṣubu laini iranlọwọ ninu iwa ipa ati ipaniyan. Eyi ti o tun pakun ẹru ipaya ati ibẹru ni ẹru itiju, nitori ẹṣẹ ara rẹ ni o mu ewu yii wa. Ireti kan ṣoṣo ti o ni ni aanu Ọlọrun, aabo rẹ kan ṣoṣo nilati jẹ adura. Sibẹ ni ipa tirẹ, ko fi ohunkohun silẹ laiṣe lati tu arakunrin rẹ loju ati lati mu ewu ti n bọ kuro. Bẹẹ gẹgẹ ni o yẹ ki awọn atẹle Kristi, bi wọn ti n sun mọ akoko idamu, o ṣe ohun gbogbo ti o yẹ lati le jẹ ki awọn eniyan o ri wọn ni ọna ti o yẹ, lati mu ẹtanu kuro, ki wọn si mu ewu ti o fẹ wu ominira ẹri ọkan kuro.

Lẹyin ti o ran idile rẹ lọ ki wọn ma baa ri idamu rẹ, Jakọbu duro ni ohun nikan lati gbadura si Ọlọrun. O jẹwọ ẹṣẹ rẹ, o si fi imoore rẹ han fun aanu Ọlọrun si oun nigba ti o n fi irẹlẹ fi majẹmu ti Ọlọrun da pẹlu awọn Baba rẹ ati ileri ti O ṣe fun ninu iran aṣalẹ ni Bẹtẹli ati ni ilẹ ajeji bẹbẹ. Igba wahala ninu igbesi aye rẹ de, ohun gbogbo wa ninu ewu. Ninu okunkun nibi ti o danikan duro si, o tẹsiwaju lati gbadura o si n rẹ ara rẹ silẹ niwaju Ọlọrun. Lojiji ọwọ kan duro le ni ejika. O ro wipe ọta ni o fẹ gba ẹmi oun, pẹlu gbogbo agbara ibinujẹ ọkan o ba ẹni ti o wa kọlu yii jijakadi. Bi oju ti bẹrẹ sii mọ, ẹni ajeji yii lo agbara rẹ ti o ju ti eniyan lọ, nigba ti o fi ọwọ kan an, ọkunrin

alagbara yii dabi arọ, o si ṣubu bi alainiranlọwọ to n bẹbẹ pẹlu ẹkun, si ọrùn olugbejako ti a ko mọ ibi ti o ti wa yii. Wayi, Jakọbu mọ wipe Angẹli majẹmu ni oun ti n ba jijakadi lati igba yii wa. Bi o tilẹ jẹ wipe o ti di amukun ti o si n jẹrora kikan kikan, ko fi erongba rẹ silẹ. O pẹ ti o ti n farada iporuuru ọkan, ibanujẹ ati idamu fun ẹṣẹ rẹ, bayi o nilati ni idaniloju wipe a ti dari ẹṣẹ oun ji. Olubẹwo lati ọrun wa ti fẹ maa lọ, ṣugbọn Jakọbu di mọ Ọ, o n bẹbẹ fun ibukun. Angẹli naa sọ pe, "Jẹ ki n maa lọ nitori ti ilẹ ti mọ," ṣugbọn alagba naa sọ pe, "Emi ki yoo jẹ ki O lọ, ayafi bi Iwọ ba bukun fun mi." Iru igboya wo, iru iduroṣinṣin ati iforiti wo ni a fihan nibi! Bi o ba ṣe wipe ifọnnu ikugbu ni eyi ni, oju ẹṣẹ ni a ba pa Jakọbu run; ṣugbọn tirẹ jẹ idaniloju ẹni ti o jẹwọ ailera ati aiyẹ rẹ, sibẹ ti o gbẹkẹle aanu Ọlọrun ti n pa majẹmu mọ.

"O ba Angẹli jijakadi, o si bori." Hosia 12:4. Nipasẹ iṛẹraẹnisilẹ, ironupiwada ati ijọwọ ara ẹni silẹ, eniyan ẹlẹṣẹ ti n baku yii ni iṣẹgun pẹlu Alagbara ọrun. O fi ọwọ rẹ ti o n gbọn di ileri Ọlọrun mu, Ọkan Ifẹ Ainipẹkun ko si le yipada kuro lọdọ ẹbẹ ẹlẹṣẹ. Gẹgẹ bi ẹri iṣẹgun rẹ, ati igbaniyanju fun awọn miran lati tẹle apẹẹrẹ rẹ, a yi orukọ rẹ pada kuro ni eyi ti o ṣe iranti fun ẹṣẹ rẹ, si eyi ti o ṣe iranti fun iṣẹgun rẹ. Wipe Jakọbu ṣẹgun pẹlu Ọlọrun jẹ idaniloju wipe yoo ṣẹgun pẹlu eniyan. Ko bẹru lati doju kọ ibinu ẹgbọn rẹ mọ, nitori pe Oluwa ni aabo rẹ.

Satani ti fi ẹsun kan Jakọbu niwaju awọn angẹli, o si n sọ wipe oun ni ẹtọ lati pa a run nitori ẹṣẹ rẹ, o mi si Esau lati lọ pade rẹ; ni akoko ijakadi alagba naa ni aṣalẹ gigun naa, Satani ṣe akitiyan lati di ẹbi rẹ ru u lati le ko irẹwẹsi ba, ki o si jawọ kuro ni ọdọ Ọlọrun. Jakọbu fẹrẹ di alainireti tan, sugbọn o mọ wipe laisi iranlọwọ lati ọrun, oun yoo ṣegbe. O ti fi tọkantọkan yipada kuro ninu ẹṣẹ nla rẹ, o si bẹbẹ fun aanu Ọlọrun. Ko ni jẹ ki a yi oun pada kuro ninu erongba oun, ṣugbọn o di Angẹli naa mu ṣinṣin, o si bẹbẹ fun ẹdun ọkan rẹ pẹlu ẹkun irora atọkanwa titi ti o fi ṣẹgun.

Bi Satani ti mi si Esau lati kọlu Jakọbu, bẹẹ gẹgẹ ni yoo ru awọn eniyan buburu soke lati pa awọn eniyan Ọlọrun run ni akoko idamu. Bi o ti fẹsun kan Jakọbu, bẹẹ gẹgẹ ni yoo ṣe fẹsun kan awọn eniyan Ọlọrun. O ri aye gẹgẹ bi ọmọ ijọba rẹ, ṣugbọn awọn ẹgbẹ kekere kan ti wọn n pa ofin Ọlọrun mọ n tako ijọba rẹ. Bi o ba le mu wọn kuro lori ilẹ, yoo ni iṣẹgun pipe. O ri wipe awọn angẹli mimọ n daabo bo wọn, o si mọ wipe a ti dari ẹṣẹ wọn ji, ṣugbọn ko mọ wipe a ti ṣe idajọ wọn ni ibi mimọ loke. O ni imọ pipe nipa ẹṣẹ ti o dan wọn wo lati da, yoo wa gbe wọn siwaju Ọlọrun pẹlu asọdun, yoo fi awọn eniyan wọnyi han bi awọn ti ko yẹ fun aanu Ọlọrun bii ti oun. O sọ wipe Oluwa ko le wuwa ododo nipa didari ẹṣẹ wọn ji nigba ti a wa pa oun

ati awọn angẹli oun run. O ri wọn gẹgẹ bi ẹran iję rẹ, o si beere ki a fi wọn fun oun lati pa wọn run.

Bi Satani ti n fẹsun kan awọn eniyan Ọlọrun nitori ẹṣẹ wọn, Oluwa a fi aaye gba a lati dan wọn wo de gongo. A o dan igboya wọn ninu Ọlọrun, igbagbọ ati iduroṣinṣin wọn wo kikankikan. Bi wọn ti wo ẹyin, ireti wọn tẹri nitori ninu gbogbo igbesi aye wọn iwọnba rere perete ni wọn ri. Wọn ni imọlara kikun nipa ailera ati aiyẹ wọn. Satani ṣe akitiyan lati dẹruba wọn pẹlu ero wipe ko si ireti fun wọn, wipe a ko ni fọ abawọn irira wọn kuro lae. O ni ireti lati pa igbagbọ wọn run ki wọn baa le jọwọ ara wọn fun idanwo ki o si mu wọn kuro ninu igbọran wọn si Ọlọrun.

Bi o tilẹ jẹ wipe awọn ọta a yi awọn eniyan Ọlọrun ka, ti wọn si pinu lati pa wọn run, sibẹ iporuuru ọkan ti wọn n jiya rẹ ki i ṣe ibẹru inunibini nitori otitọ wọn bẹru boya wọn koi ti i ronupiwada kuro ninu gbogbo ẹṣẹ wọn, ati pe nipasẹ aṣiṣe inu wọn, wọn le baku lati ri imuṣẹ ileri Olugbala: Emi "yoo pa ọ mọ kuro ninu wakati idanwo, eyi ti n bọwa sori aye." Ifihan 3:10. Bi wọn ba le ri idaniloju idariji, wọn ko ni bẹru lati jiya tabi lati ku, ṣugbọn bi wọn ba jẹ alaiyẹ, ti wọn si padanu ẹmi wọn nitori abawọn iwa inu wọn, nigba naa ni a o kẹgan orukọ mimọ Ọlọrun.

Ni gbogbo ọna wọn n gbọ nipa pipete ọtẹ, wọn si n ri iṣọwọṣiṣẹ takuntakun iṣọtẹ, ifẹ gbigbona dide ninu wọn, ikaanu atọkanwa lati da iyapa nla yii duro ki a si fi opin si iwa buburu awọn eniyan buburu. Ṣugbọn nigba ti wọn n bẹbẹ pẹlu Ọlọrun lati dawọ iṣọtẹ duro, o jẹ pẹlu imọlara itiju nla wipe awọn funra wọn ko ni agbara mọ lati doju ija kọ igbi iwa buburu naa, ki wọn si da pada. Wọn ro wipe bi o ba ṣe wipe wọn ti n fi igba gbogbo lo gbogbo agbara wọn ninu iṣẹ Kristi ni, ti wọn n tẹsiwaju lati agbara de agbara, ogun Satani ki ba ti ni agbara ti ọ pọ lati ṣẹgun wọn.

Wọn jẹ ọkan wọn niya niwaju Ọlọrun, wọn n tọka si ironupiwada ti wọn ti ni fun ọpọlọpọ ẹṣẹ atẹyinwa, wọn si n bẹbẹ pẹlu ileri Olugbala: "Jẹ ki o di agbara Mi mu ki o le ba Mi laja; yoo si ba Mi laja." Aisaya 27:5. Igbagbọ wọn ko baku nitori pe a ko tete dahun si adura wọn. Bi o tilẹ jẹ wipe wọn n jiya ipaya, ibẹru ati iporuuru ọkan, wọn ko dawọ ẹbẹ wọn duro. Wọn di ọwọ mọ okun Ọlọrun bi Jakọbu ti di Angẹli naa mu, iro ọkan wọn si ni: "Emi ki yoo jẹ ki O lọ ayafi bi Iwọ ba bukun fun mi."

Bi o ba ṣe wipe Jakọbu ko yipada kuro ninu ẹṣẹ rẹ nipa fifi èrú gba ogun ibi ni, Ọlọrun i ba ma gbọ adura rẹ ki O si fi aanu pa ẹmi rẹ mọ. Bẹẹ gẹgẹ ni ni akoko idamu, bi awọn eniyan Ọlọrun ba ni ẹṣẹ ti wọn ko jẹwọ niwaju wọn, nigba ti ibẹru ati iporuuru ọkan ba n jẹ

wọn niya, a o bori wọn; iporuuru ọkan a ge igbagbọ wọn kuro, wọn ko si ni ni igboya lati bẹbẹ fun idasilẹ lọdọ Ọlọrun. Ṣugbọn nigba ti wọn ni imọlara ti o jinlẹ nipa aṣiṣe wọn, wọn ko ni ẹṣẹ kankan ti wọn gbe pamọ lati fihan. Ẹṣẹ wọn ti ṣaaju wọn lọ si idajọ a si ti pa wọn rẹ, wọn ko si le ranti wọn.

Satani mu ki ọpọlọpọ o gbagbọ wipe Ọlọrun a fi oju fo aiṣootọ wọn ninu ohun kekere ile aye koja, ṣugbọn Oluwa fihan ninu iṣesi Rẹ, pẹlu Jakọbu wipe Oun ko ni fọwọ si tabi farada iwa buburu. Gbogbo awọn ti wọn n tiraka lati ṣe awawi nipa ẹṣẹ wọn tabi lati bo wọn mọlẹ, ti wọn si jẹ ki a fi wọn silẹ ninu iwe ọrun, ni aijẹwọ, ti a ko si dari wọn ji, ni Satani a bori wọn. Bi ijẹwọ wọn ba ti ga to ati bi ipo ti wọn wa ba ti lọla to, bẹẹ ni iwa wọn a ṣe buru to niwaju Ọlọrun, bẹẹ gẹgẹ ni iṣẹgun ọta nla wọn a ti daju to. Awọn ti wọn n fa imurasilẹ fun ọjọ Ọlọrun seyin ko le ri i ni akoko idamu tabi ni akoko miran lẹyin rẹ. Ko si ireti fun iru awọn eniyan bawọnyi.

Awọn ti wọn pe ara wọn ni Kristẹni ti wọn de akoko rogbodiyan ikẹyin ẹlẹru yii laimurasilẹ jẹwọ ẹṣẹ wọn ninu ibẹru wọn pẹlu iporuuru ọkan, nigba ti inu awọn eniyan buburu n dun nitori iporuuru ọkan wọn. Awọn ijẹwọ yii jẹ nnkan naa pẹlu ti Esau tabi ti Judasi. Awọn ti wọn ṣe wọn, kaanu fun abayọri irekọja, ki i si i ṣe ẹbi rẹ. Wọn ko ni ikaanu tootọ, ko si ikorira fun ẹṣẹ. Wọn jẹwọ ẹṣẹ wọn nitori ibẹru ijiya, ṣugbọn bi i ti Farao igbaani, wọn a pada sinu ìpe Ọrun nija wọn bi a ba mu idajọ kuro.

Itan Jakọbu tun jẹ idaniloju wipe Ọlọrun ko ni kọ awọn ti a tanjẹ, ti a danwo, ti a si ju sinu ẹṣẹ, ṣugbọn ti wọn pada si ọdọ Rẹ pẹlu ironupiwada tootọ silẹ. Nigba ti Satani n wọna lati pa ẹgbẹ yii run, Ọlọrun a ran awọn angẹli Rẹ lati tu wọn ninu ati lati daabo bo wọn ni akoko wahala. Awọn ikọlu Satani gbona wọn si daju, awọn ẹtan rẹ lagbara, ṣugbọn oju Oluwa wa lara awọn eniyan Rẹ, eti Rẹ si n gbọ igbe wọn. Ijiya wọn pọ, o dabi ẹnipe ina ileru fẹrẹ jo wọn run, ṣugbọn Ẹni ti n fọ wọn a mu wọn jade bi wura ti a danwo ninu ina. Ifẹ Ọlọrun fun awọn ọmọ Rẹ ni akoko idanwo nla yii nipọn, o si ṣe jẹjẹ bi ti akoko igbadun wọn; ṣugbọn o yẹ ki a ju wọn sinu ina ileru, a nilati mu ifarawe aye inu wọn kuro, ki aworan Kristi baa le farahan ni pipe.

Akoko wahala ati iporuuru ọkan ti o wa niwaju wa yoo nilo igbagbọ ti o le farada aarẹ, idaduro, ati ẹbi—igbagbọ ti ki yoo baku bi a ba tilẹ n dan an wo kikankikan. A fun gbogbo eniyan ni akoko oore ọfẹ lati mura silẹ fun akoko naa. Jakọbu ṣẹgun nitori pe o ni iforiti, o si ṣe ipinu. Iṣẹgun rẹ jẹ ẹri fun agbara adura awiiyannu. Gbogbo awọn ti wọn di ileri Ọlọrun mu gẹgẹ bi o ti ṣe, ti wọn si ṣe e tọkantọkan pẹlu iforiti bi o ti ṣe e, yoo ṣe aṣeyọri gẹgẹ bi o ti ṣe. Awọn ti wọn

ko ṣetan lati sẹ ara wọn, lati kẹdun niwaju Ọlọrun, lati gba adura gigun latọkanwa fun ibukun Rẹ, ko ni ri gba. Jijijadu pẹlu Ọlọrun—awọn perete ni wọn mọ itumọ rẹ! Awọn ti wọn na ọkan wọn jade si Ọlọrun pẹlu ifẹ ọkan gbigbona titi ti gbogbo agbara fi na sita ti kere to. Nigba ti igbi iporuuru ọkan ti ẹnu ko le sọ ba ru kọja ẹni ti n bẹbẹ, iwọnba awọn melo ni wọn n fi igbagbọ ti ko baku dimọ ileri Ọlọrun.

Awọn ti wọn n lo igbagbọ kekere nisinsinyii wa ninu ewu nla lati ṣubu si abẹ agbara itanjẹ Satani ati aṣẹ ti n dari ẹri ọkan. Ani bi wọn tilẹ fi ara da idanwo naa, wọn yoo wa ninu idamu ati iporuuru ọkan ti o jinlẹ ni akoko idamu, nitori pe ki i ṣe iwa wọn ni lati gbẹkẹle Ọlọrun. Ẹkọ igbagbọ ti wọn kọ lati kọ ni a pọn dandan fun wọn lati kọ labẹ ooru gbigbona ti iporuuru ọkan.

Bayi a nilati so ara wa pọ mọ Ọlọrun nipa ṣiṣe ayẹwo awọn ileri Rẹ. Awọn angẹli ṣe akọsilẹ gbogbo adura otitọ ti o ti inu ọkan wa. A nilati yan lati kọ itẹra-ẹni-lọrun onimọ-ti-ara-ẹni-nikan silẹ ju lati kọ biba Ọlọrun sọrọ silẹ lọ. Aini ti o jinlẹ julọ, isẹra ẹni ti o ga julọ ti O fọwọ si, ṣi san ju ọrọ, ọla, irọrun, ati ibadọrẹ laisi rẹ lọ. A nilati wa akoko lati gbadura. Bi a ba jẹ ki ohun aye o gba ọkan wa, Oluwa le fun wa ni akoko nipa mimu orisa wura, ile tabi ilẹ ọlọra wa kuro.

A ko ni tan awọn ọdọ sinu ẹṣẹ bi wọn ko ba rin ni ọnakọna ayafi eyi ti wọn a tile beere ibukun Ọlọrun. Bi awọn iranṣẹ ti wọn ni ikilọ ẹlẹru ti o kẹyin si araye a ba gbadura fun ibukun Ọlọrun, ki i ṣe ni ọna tutu, aibikita, bi ọlẹ, ṣugbọn pẹlu itara ati ni igbagbọ, bi Jakọbu ti ṣe, wọn a ri ọpọlọpọ aaye nibi ti wọn a ti le sọ pe: "Mo ti ri Ọlọrun lojukoju, a si da ẹmi mi si." Jẹnẹsisi 32:30. Ọrun a ri wọn gẹgẹ bi ọmọ alade ti o ni agbara lati ṣẹgun pẹlu Ọlọrun ati eniyan.

"Akoko idamu, iru eyi ti koi tii si ri," yoo de sori wa laipẹ, a si nilo iriri ti a ko ni bayi, eyi ti ọpọlọpọ ṣe imẹlẹ lati ni. O saba maa n ṣẹlẹ wipe idamu maa n tobi nigba ti a ba n reti rẹ ju igba ti o da be bawa lọ, ṣugbọn ki i ṣe bii ti wahala ti o wa niwaju wa. Alaye ti o han kedere julọ ko le ṣe afihan bi iṣẹlẹ naa a ti tobi to. Ni akoko idanwo naa, gbogbo ọkan ni o nilati duro fun ara rẹ niwaju Ọlọrun. "Bi Noa, Danieli ati Jobu" ba wa ni ilẹ naa, "bi ẹmi Mi ti wa ni Oluwa Ọlọrun wi, wọn ki yoo le gba ọmọkunrin tabi ọmọbinrin la; ṣugbọn wọn a fi ododo wọn gba ọkan ara wọn la." Isikieli 14:20.

Nisinsinyii, nigba ti Olu Alufa nla wa si n ṣe etutu fun wa, a nilati wa lati di pipe ninu Kristi. A ko le mu ki Kristi yọnda ara Rẹ fun agbara idanwo, ani bi o tilẹ jẹ ninu ero lasan. Satani n wa ibi ti o ti le ri aaye ninu ọkan eniyan nipa awọn ẹṣẹ ti a fẹran, eyi ti o n fun awọn idanwo rẹ lagbara. Kristi sọ nipa ara Rẹ: "Ọmọ alade aye yii wa, ko si ni ohun kan ninu Mi." Johanu 14:30. Satani ko le ri ohun kan ti o le fun ni

iṣẹgun ninu Ọmọ Ọlọrun. O pa ofin Baba Rẹ mọ, ko si si ẹṣẹ kan ninu Rẹ ti o le ran Satani lọwọ. Ipo ti ẹnikẹni ti yoo duro ni akoko idamu nilati wa niyii.

Ni akoko yii a nilati ya ara wa sọtọ kuro ninu ẹṣẹ nipa igbagbọ ninu ẹjẹ Kristi ti n wẹ ẹṣẹ nu. Olugbala wa ọwọn n pe wa lati so ara wa pọ mọ Oun, lati so ailera wa pọ mọ agbara Rẹ, aimọkan wa pọ mọ ọgbọn Rẹ, aiye wa pọ mọ ikayẹ Rẹ. Ipese Ọlọrun jẹ ile ẹkọ nibi ti a nilati kọ ẹkọ ọkan tutu ati irẹlẹ Jesu. Oluwa n gbe afojusun tootọ wa siwaju wa, ki i si i ṣe ọna ti awa i ba yan, eyi ti o rọwa lọrun ti o si dun mọ wa. O wa lọwọ wa lati fi ọwọsowọpọ pẹlu awọn ọna ti Ọrun n lo ninu iṣẹ a ti yi iwa pada si ti apẹẹrẹ ọrun. Ko si ẹni ti o le kọ iṣẹ yii silẹ tabi ti o le fa a sẹyin laiko ewu nla ba ọkan ara rẹ.

Apostoli Johanu ninu iran gbọ ohun nla kan ni ọrun wipe: "Egbe ni fun awọn olugbe aye ati okun! nitori ti eṣu sọkalẹ tọ yin wa pẹlu ibinu nla, nitori ti o mọ wipe akoko kukuru ni oun ni." Ifihan 12:12. Awọn iṣẹlẹ ti wọn fa igbe lati ọrun wa yii jẹ eyi ti o lẹru. Ibinu Satani n pọ si bi akoko rẹ ti n kere si, iṣẹ itanjẹ ati iparun rẹ yoo si de gongo ni akoko idamu.

Awọn iṣẹlẹ ẹlẹru ti wọn kọja oye eniyan yoo farahan loju ọrun laipẹ ni ẹri si agbara awọn ẹmi aimọ ti n ṣiṣẹ iyanu. Awọn ẹmi eṣu yoo jade lọ si ọdọ awọn ọba aye ati si gbogbo aye, lati dè wọn mọ inu ẹtan, wọn a si maa ti wọn lati darapọ mọ Satani ninu ijakadi rẹ ti o kẹyin pẹlu ijọba ọrun. Nipasẹ awọn aṣoju wọnyi, awọn alaṣẹ ati awọn ọmọ ilu papọ ni a o tanjẹ. Awọn eniyan a dide ti wọn pe ara wọn ni Kristi funra Rẹ, ti wọn a maa pe ara wọn ni orukọ ti o tọ si Olurapada aye, wọn a si maa gba ijọsin ti o yẹ fun. Wọn a ṣe iṣẹ iyanu iwosan, wọn a si kede wipe wọn ni ifihan lati ọrun eyi ti o tako ẹri Iwe Mimọ.

Gẹgẹ bi iṣẹ rẹ ti o ga ju ninu iṣẹ itanjẹ, Satani funra rẹ yoo farahan bii Kristi. Ijọ ti n sọ fun igba pipẹ wipe oun n wọna fun wiwa Olugbala gẹgẹ bi imuṣẹ ireti rẹ. Bayi atanniijẹ nla naa a mu ki o han wipe Kristi ti wa. Ni orişirişi ibi ni aye, Satani a fi ara rẹ han laarin awọn eniyan bi ẹda alagbara ti o n tàn, ti o jọ apejuwe Ọmọ Ọlọrun ti Johanu ṣe ninu Ifihan 1:13—15. Ogo ti o yika kọja ohunkohun ti oju eniyan tii ri ri lọ. Ariwo iṣẹgun n lọ ninu afẹfẹ: "Kristi ti de! Kristi ti de!" Awọn eniyan a dọbalẹ ni ijọsin niwaju rẹ, nigba ti a gbe ọwọ rẹ soke a si bukun fun wọn bi Kristi ti ṣe bukun fun awọn ọmọ ẹyin Rẹ nigba ti O wa lori ilẹ aye. Ohùn rẹ fẹlẹ, o si rẹlẹ, sibẹ, o kun fun iro. Pẹlu ohun irẹlẹ ati ikaanu o kọni ni diẹ lara awọn otitọ oloore ọfẹ ti Kristi fi kọni; o wo aisan awọn eniyan san, pẹlu iwa Kristi ti o gbe wọ, a sọ wipe oun ti yi ọjọ Isinmi pada si ọjọ Sọnde, a wa paṣẹ fun gbogbo eniyan lati bọwọ fun ọjọ ti oun ti bukun fun. A sọ wipe awọn ti wọn n tẹsiwaju

lati maa pa ọjọ keje mọ n sọ ọrọ odi si orukọ oun nipa kikọ lati tẹti si awọn angẹli oun ti oun ran si wọn pẹlu imọlẹ ati otitọ. Eyi ni itanjẹ ti o lagbara ti o fẹrẹ ju gbogbo itanjẹ lọ. Bi awọn ara Samaria tí Simoni Magu tanjẹ, awọn eniyan, lati kekere titi de nla, tẹti si ìraniníye rẹ, wọn n wipe: “Agbara nla Ọlọrun” ni yii. Iṣe 8:10.

Ṣugbọn a ki yoo ṣi awọn eniyan Ọlọrun dari. Awọn ikọni kristi eke yii ko wa ni ibamu pẹlu Iwe Mimọ. Awọn ti n jọsin ẹranko naa ati aworan rẹ ni o ṣe ibukun fun, ẹgbẹ gan an pato ti Bibeli sọ wipe a o tu ibinu Ọlọrun laini abula si lori.

Siwaju si, a ko gba Satani laaye lati ṣe ayederu bi Kristi yoo ti wa. Olugbala ti ṣe ikilọ fun awọn eniyan Rẹ nipa itanjẹ lori koko ọrọ yii, O si ti sọ ọ ni kedere bi wiwa Oun lẹẹkeji yoo ti ri. “Kristi eke ati woli eke yoo dide, wọn yoo si fi iṣẹ ami ati iṣẹ iyanu nla han; yoo pọ to bẹẹ gẹẹ ni pe bi o ba ṣe e ṣe, wọn yoo tan awọn ayanfẹ paapa jẹ. . . . Nitori naa, bi wọn ba sọ fun yin, Kiyesi O wa ni aṣálẹ, ẹ maṣe lọ: kiyesi O wa ninu iyẹwu, ẹ maṣe gbagbọ. Nitori bi mọnamọna ti n jade wa lati ila oorun ti n tan ani titi de iwọ oorun, bẹẹ ni wiwa Ọmọ eniyan yoo ti ri.” Matiu 24:24—27, 31; 25:31; 1 Tẹsalonika 4:16, 17. Ko si aaye lati ṣe ayederu wiwa yii. Gbogbo aye ni yoo mọ—gbogbo aye ni yoo ri.

Kiki da awọn ti wọn jẹ akẹkọ Iwe Mimọ tootọ, ti wọn si ti gba ifẹ fun otitọ nikan ni a o daabo bo kuro ninu itanjẹ alagbara naa ti n ko araye nigbekun. Nipasẹ ẹri Bibeli, awọn wọnyi a da atanniijẹ mọ ninu iboju rẹ. Gbogbo eniyan ni akoko idanwo yoo de ba. Nipa jíjọ idanwo, a o fi Kristẹni ojulowo han. Ṣe awọn eniyan Ọlọrun fẹsẹ mulẹ daradara ninu ọrọ Rẹ bayii debi pe wọn ko ni gba ohun ti wọn ba ri gbọ bi? Ninu iru idanwo yii, ṣe wọn a di mọ Bibeli ani Bibeli nikan ṣoṣo? Bi o ba ṣe e ṣe Satani yoo di wọn lọwọ lati wa ni imurasilẹ lati le duro ni ọjọ naa. Yoo ṣe ohun gbogbo to bẹẹ gẹẹ lati le di wọn lọna, yoo fi ọrọ aye de wọn mọlẹ, yoo mu ki wọn o gbe ẹru wuwo ti n kaarẹ bani, ki ọkan wọn le kun fun wahala aye yii ti ọjọ naa a si de ba wọn bi olè.

Bi aṣẹ lati ọdọ orişirişi awọn alaṣẹ ẹsin Kristẹni, ni ilodi si awọn ti n pa ofin mọ, ti n jade lati maṣe daabo ijọba bo wọn, ki a si fi wọn silẹ fun awọn ti wọn ba fẹ pa wọn run, awọn eniyan Ọlọrun a sa kuro ninu awọn ilu nla ati awọn ileto, wọn a si parapọ ni ẹgbẹẹgbẹ, wọn a maa gbé nibi isọdahoro ti o pamọ. Ọpọ ni yoo ri ibi aabo ninu ibi kọlọfin oke. Bi awọn Kristẹni afonifoji Piedmont, wọn a fi ibi giga aye ṣe ibi aabo wọn, wọn a si dupe lọwọ Ọlọrun fun “ibi aabo apata.” Aisaya 33:16. Ṣugbọn ọpọlọpọ lati gbogbo orilẹ ede, ati laarin gbogbo eniyan, ati giga ati kukuru, ati ọlọrọ ati otoṣi, ati dudu ati funfun ni a o sọ sinu igbekun ti o buru jọjọ. Awọn ayanfẹ Ọlọrun a

la ọjọ aarẹ kọja, ninu ẹwọn, ti a fi irin inu ọgba ẹwọn ka wọn mọ, ti a dajọ iku fun, ti a si fi awọn miran silẹ lati pebi ku ninu ihamọ ẹlẹgbin ti o ṣokunkun. Ko si eti eniyan ti o gbọ igbe wọn, ko si ọwọ eniyan ti o ṣetan lati ran wọn lọwọ.

Ṣe Oluwa a gbagbe awọn eniyan Rẹ ni wakati idanwo yii bi? Njẹ O gbagbe Noah nigba ti idajọ wa sori awọn olugbe aye ṣaaju ikun omi? Njẹ O gbagbe Lọti nigba ti ina wa lati ọrun lati pa awọn ilu nla ni pẹtẹlẹ run? Njẹ O gbagbe Josẹfu ti awọn abọrisa yi kaakiri ni Ijibiti? Njẹ O gbagbe Elija nigba ti ẹ̀jẹ́ Jesebeli dẹruba a pẹlu atubọtan awọn woli Baali? Njẹ O gbagbe Jeremaya ninu iwo ẹlẹgbin to ṣokunkun ninu ile tubu? Njẹ O gbagbe awọn akọni mẹta ninu ina ileru? tabi Danieli ninu iwo kiniun?

“Sioni wipe, Oluwa ti kọ mi silẹ, Oluwa mi si ti gbagbe mi. Njẹ obinrin ha le gbagbe ọmọ ọmu rẹ, ti ki yoo fi kaanu fun ọmọ inu rẹ? Sibẹ, wọn le gbagbe, ṣugbọn Emi ki yoo gbagbe rẹ. Kiyesi, Mo ti kọ ọ sinu atẹlẹwọ ọwọ Mi.” Aisaya 49:14—16. Oluwa awọn ọmọ ogun ti wipe: “Ẹni ti o ba fi ọwọ kan ọ fọwọ kan ẹyin oju Rẹ.” Sekaraya 2:8.

Bi o tilẹ jẹ wipe awọn ọta sọ wọn sinu tubu, sibẹ ogiri inu tubu ko le di ibasọrọ laarin ọkan wọn ati Kristi lọwọ. Ẹni ti O ri gbogbo ailera, ti O mọ gbogbo idanwo, ga ju gbogbo agbara aye lọ, awọn angẹli a si wa si ọdọ wọn ninu tubu ti wọn danikan wa, pẹlu imọlẹ ati alaafia lati ọrun. Ọgba ẹwọn yoo dabi aafin nitori pe awọn ọlọrọ ninu igbagbọ ni wọn n gbe nibẹ, ogiri ti o ṣokunkun a si mọlẹ pẹlu imọlẹ ọrun bi igba ti Pọlu ati Sila gbadura ti wọn n kọrin iyin ni oru ninu ile tubu ni Filipi.

Idajọ Ọlọrun a wa sori awọn ti wọn n wa ọna lati fiya jẹ ati lati pa awọn eniyan Rẹ run. Ifarada ọlọjọgbọọrọ Rẹ pẹlu awọn eniyan buburu ti kì wọn laya ninu ẹṣẹ, ṣugbọn ijiya wọn pẹlu daju o si lẹru nitori ti a fa a sẹyin. “Oluwa yoo dide gẹgẹ bi ti Oke Pẹrasimu yoo binu bii ti afonifoji Gibeoni, ki O le ṣe iṣẹ ajeji Rẹ; ki O si mu iṣẹ Rẹ wa si imuṣẹ, iṣẹ ajeji Rẹ.” Aisaya 28:21. Iṣẹ ijẹniniya jẹ iṣẹ ajeji si Ọlọrun alaanu wa. Oluwa jẹ “alaanu ati oloore ọfẹ, onipamọra ti o pọ ni oore ati otitọ, . . . ti n dari aisedeede ati irekọja ati ẹṣẹ ji.” Sibẹ ko ni “jẹki ẹlẹbi o lọ lọfẹ.” “Oluwa lọra lati binu, O pọ ni agbara, ko si ni da ẹlẹṣẹ silẹ lae.” Ẹksodu 34:6, 7; Nahumu 1:3. Pẹlu awọn ohun ẹru ni ododo yoo da aṣẹ ofin Rẹ ti a n tẹ loju lare. A le wo bi ijiya ti o n duro de awọn ẹlẹṣẹ yoo ti gbona to pẹlu bi Oluwa ti lọra lati ṣe idajọ. Orilẹ ede ti O ni ifarada fun ti ki yoo jẹ niya titi ti a fi kun odiwọn ẹṣẹ rẹ niwaju Ọlọrun, yoo mu ago ibinu laisi aanu nikẹyin.

Nigba ti Kristi ba ṣiwọ ibalaja ninu ibi mimọ loke, a o tu ibinu laisi abula ti a ṣeleri fun awọn ti wọn jọsin ẹranko naa ati aworan rẹ ti

wọn si gba ami rẹ (Ifihan 14:9, 10) jade. Ijiya ti o wa sori Ijibiti nigba ti Ọlọrun fẹ da awọn ọmọ Israeli silẹ fẹ fi ara jọ awọn idajọ ti o lagbara julọ ti o tun pọ, eyi ti yoo wa si ori aye ni kete ṣaaju ki a to da awọn eniyan Ọlọrun silẹ. Onifihan sọ ni ṣiṣe alaye awọn ijiya ẹlẹru naa pe: "Egbò kikẹ ti o dibajẹ si da sori awọn eniyan ti wọn ni ami ẹranko naa, ati sori awọn ti wọn n jọsin aworan rẹ." Òkun "dabi ẹjẹ oku eniyan: gbogbo ohun alaaye ti n bẹ ninu okun si ku." "Odo ati orisun awọn omi . . . si di ẹjẹ." Bi awọn ijiya wọnyi ti lagbara to, a si dá ododo Ọlọrun lare. Angẹli Ọlọrun wipe: "Olododo ni Iwọ, Oluwa . . . nitori pe Iwọ ṣe idajọ bayii. Nitori ti wọn ti ta ẹjẹ awọn eniyan mimọ ati ti awọn woli silẹ, Iwọ si fun wọn ni ẹjẹ mu; nitori pe wọn yẹ." Ifihan 16:2—6. Nipa didajọ iku fun awọn eniyan Ọlọrun, wọn ti jẹbi ẹjẹ wọn lootọ afi bi ẹnipe wọn fi ọwọ wọn ta a silẹ. Ni ọna kan naa Kristi sọ pe awọn Ju ni akoko Rẹ jẹbi ẹjẹ awọn eniyan mimọ ti a ti ta silẹ lati akoko Abeli, nitori ti wọn ni iru ẹmi kan naa, wọn si n wa lati ṣe iru iṣẹ kan naa pẹlu awọn ti wọn pa awọn woli wọnyi.

Ninu ijiya ti o tẹle, a fun oorun ni agbara "lati fi ina jo awọn eniyan lara. Ooru nla si jo awọn eniyan lara." Ẹsẹ 8, 9. Awọn woli ṣe apejuwe ipo aye ni akoko ẹlẹru yii: "Ilẹ naa n ṣọfọ; . . . nitori ti ikore ṣègbé. . . . Gbogbo igi oko rọ: nitori ti ayọ rọ kuro ni ọdọ awọn ọmọ eniyan. Eso n kẹ labẹ erupẹ ilẹ, a sọ àká di ahoro. . . . Ẹ wo bi awọn ẹranko ti n gbin! agbo ẹran n damu, nitori ti wọn ko ni eweko. . . . Awọn odo omi gbẹ, ina si ti jo papako ni aginju run." "Orin tẹmpili yoo jẹ hihu ni ọjọ naa, ni Oluwa wi: oku pupọ ni yoo wa ni ibi gbogbo; wọn o maa ju wọn sode pẹlu idakẹjẹẹ." Joeli 1:10—12; Amosi 8:3.

Awọn iyọnu yii ko kari aye, ki gbogbo awọn olugbe aye ma baa parun tan patapata. Sibẹ wọn a jẹ ijiya ti o lẹru julọ ti eniyan tii ri ri. Gbogbo idajọ ti wọn wa sori awọn eniyan, ṣaaju ki akoko oore ọfẹ to pari ni a fi aanu la. Ẹjẹ Kristi ti n ṣe ibalaja n daabo bo ẹlẹṣẹ lati maṣe gba ijiya ẹbi rẹ ni kikun; ṣugbọn ni idajọ ti o kẹyin, a o tu ibinu jade sita laisi aanu.

Ni ọjọ naa, ọpọlọpọ ni yoo fẹ lati ri idaabo bo aanu Ọlọrun ti wọn ti n gan fun igba pipẹ. "Kiyesi ọjọ naa n bọ, ni Oluwa wi, ti Emi yoo ran iyan si ilẹ naa, ki i ṣe iyan fun akara, tabi ongbe fun omi, ṣugbọn ti gbigbọ ọrọ Oluwa: wọn yoo si rin lati okun de okun, ati lati ariwa ani titi de ila oorun, wọn yoo sa sọtun sosi lati wa ọrọ Oluwa, wọn ki yoo si ri i." Amosi 8: 11, 12.

Awọn eniyan Ọlọrun ki yoo bọyọ lọwọ ijiya, ṣugbọn nigba ti a n ṣe inunibini si wọn ti wọn si wa ninu idamu, nigba ti wọn n farada ijiya ati aini onjẹ, a ko ni fi wọn silẹ lati parun. Ọlọrun ti o pese fun Elija ko ni kọ ọkan ninu awọn ọmọ Rẹ ti n fi ara wọn rubọ silẹ. Ẹni ti O mọ iye

irun ori wọn yoo pese fun wọn, ni akoko iyan a o tẹ wọn lọrun. Nigba ti awọn eniyan buburu n ku nitori ebi ati ajakalẹ arun, awọn angẹli a daabo bo awọn olododo, wọn a si pese fun aini wọn. Si ẹni ti n "rin ọna ododo" ni a ṣe ileri yii fun: "A o fun ni onjẹ; omi rẹ yoo si daju." " Nigba ti awọn otọṣi ati alaini ba n wa omi, ti ko si si, ti ahọn wọn baku fun ongbẹ, Emi Oluwa yoo gbọ wọn, Emi Ọlọrun Israeli ki yoo kọ wọn silẹ." Aisaya 33:15, 16; 14:17.

"Bi igi ọpọtọ ki yoo tilẹ tanna, ti eso ko si ninu ajara; iṣẹ igi olifi yoo baku, oko ki yoo si mu onjẹ wa; a o ge agbo ẹran kuro ninu agbo, ọwọ ẹran ki yoo si si ni ibuso mọ;" sibẹ awọn ti wọn n bẹru rẹ "yoo yọ ninu Oluwa" wọn a si yọ ninu Ọlọrun igbala wọn. Habakuku 3:17, 18.

"Oluwa ni olusọ rẹ: Oluwa ni aabo ni ọwọ ọtun rẹ. Oorun ki yoo pa ọ ni igba ọsan, tabi oṣupa ni igba oru. Oluwa yoo pa ọ mọ kuro ninu ewu gbogbo: yoo pa ọkan rẹ mọ." "Yoo gba ọ lọwọ ikẹkun pẹyẹpẹyẹ, ati lọwọ ajakalẹ arun buburu. Yoo da iyẹ Rẹ bo ọ, iwọ yoo si gbẹkẹle abẹ iyẹ apa Rẹ: otitọ Rẹ yoo jẹ asa ati aabo rẹ. Iwọ ki yoo bẹru ijamba ni igba oru; tabi fun ọfa ti n fo ni igba ọsan; tabi fun ajakalẹ arun ti n rin ninu okunkun; tabi fun iparun ti n panirun ni ọsan gangan. Ẹgbẹrun yoo ṣubu ni ẹgbẹ rẹ, ati ẹgbẹrun mẹwa ni ẹgbẹ ọtun rẹ; ṣugbọn ki yoo de ọdọ rẹ. Kikida oju rẹ ni iwọ yoo fi kiye si, ti iwọ yoo si fi ri èrè awọn ẹni buburu. Nitori ti iwọ ti fi Oluwa, Ẹni ti i ṣe aabo mi, ani Ẹni Giga julọ, ṣe ibugbe rẹ, ibikibi ki yoo ṣubu lu ọ, bẹẹ ni arunkarun kan ki yoo sunmọ ibugbe rẹ." O. Dafidi 121:5—7; 91:3—10.

Sibẹ ni oju eniyan yoo dabi ẹnipe awọn eniyan Ọlọrun fẹ fi ẹjẹ wọn ṣe edidi fun ẹri wọn bi i ti awọn ajẹriku ṣaaju wọn. Awọn funra wọn bẹrẹ si nii bẹru wipe Oluwa ti fi wọn silẹ lati ṣubu ni ọwọ awọn ọta wọn. O jẹ akoko irora ti o lẹru. Lọsan ati loru, wọn n kigbe si Ọlọrun fun idasilẹ. Inu awọn eniyan buburu n dun, wọn n kigbe ifinisẹsin: "Nibo ni igbagbọ yin wa nisinsinyii? Kilo de ti Ọlọrun ko gba yin kuro lọwọ wa bi ẹyin ba jẹ eniyan Rẹ nitootọ?" Ṣugbọn awọn to n duro wọnyi ranti Jesu to n ku lori agbelebu Kalfari ti awọn olu alufa ati awọn alaṣẹ n kigbe pẹlu ẹgan: "O gba awọn miran la; ṣugbọn ko le gba ara Rẹ la. Bi O ba jẹ Ọba Isreali, jẹki O sọkalẹ lati ori agbelebu, awa yoo si gba a gbọ." Matiu 27:42. Bi Jakọbu, gbogbo wọn ni wọn n ba Ọlọrun jijakadi. Oju wọn fi ijakadi inu wọn han. Oju gbogbo wọn joro. Sibẹ wọn ko ṣiwọ ẹbẹ atọkanwa.

Bi awọn eniyan ba le riran pẹlu oju ọrun, wọn a ri ẹgbẹ awọn angẹli ti wọn pọ ni agbara ti wọn duro yi awọn ti wọn pa ọrọ suuru Kristi mọ ka. Pẹlu ibakẹdun oniwajẹjẹ awọn angẹli wo iporuuru ọkan wọn, wọn si gbọ adura wọn. Wọn duro de ọrọ Adari wọn lati yọ wọn kuro ninu ewu ti wọn wa. Ṣugbọn wọn nilati duro fun igba diẹ si.

Awọn eniyan Ọlọrun nilati mu ninu ago naa, ki a si ri wọn bọmi pẹlu itẹbọmi naa. Ifasẹyin gan, ti o ni wọn lara pupọpupọ, ni idahun ti o dara julọ fun adura wọn. Bi wọn ti n ṣe akitiyan lati duro pẹlu igbẹkẹle fun Oluwa lati ṣiṣẹ, wọn fi igbagbọ, ireti, ati suuru han eyi ti wọn ko fihan to ninu iriri ẹsin wọn. Sibẹ, nitori awọn ayanfẹ, a ge akoko idamu naa kuru. "Ṣe Ọlọrun ko ni gbẹsan nitori awọn ayanfẹ Rẹ, ti wọn n kigbe pe E lọsan ati loru? . . . Mo sọ fun yin yoo gbẹsan wọn kankan." Luku 18:7, 8. Opin yoo yara de kankan ju bi awọn eniyan ti n reti rẹ lọ. A o ko alikama jọ ni ìtí lati ko wọn si inu aka Ọlọrun, a o si ko epo jọ bi igi idana fun ina iparun.

Awọn oluṣọna ọrun ti wọn jẹ olootọ si ojuṣe wọn tẹsiwaju lati maa ṣọna. Bi o tilẹ jẹ wipe a ti pa aṣẹ kan gboogi eyi ti o sọ akoko ti a o ṣe iku pa gbogbo awọn ti n pa ofin mọ, awọn ọta wọn ni ibomiran a fẹ ki ọjọ naa yara de kankan, ki akoko ti a yan o to de, wọn yoo gbiyanju lati gba ẹmi wọn. Ṣugbọn ko si ẹni ti o le la aarin awọn oluṣọna alagbara ti wọn yi awọn olootọ ka kọja. A kọ lu awọn miran bi wọn ti n salọ kuro ninu awọn ilu nla ati ileto, ṣugbọn ida ti a gbe soke si wọn da, o si jabọ bii koriko. Awọn angẹli gbeja awọn miran ni irisi bi awọn ologun.

Ni gbogbo igba, Ọlọrun n ṣiṣẹ nipasẹ awọn angẹli mimọ fun iranlọwọ ati igbala awọn eniyan Rẹ. Awọn ẹda ọrun n ko ipa takuntakun ninu ọrọ awọn eniyan. Wọn fi ara han pẹlu aṣọ ti n dan bi mọnamọna, wọn wa ni irisi eniyan gẹgẹ bi arinrinajo. Awọn angẹli farahan ni irisi eniyan si awọn eniyan Ọlọrun. Wọn a sinmi bi ẹni ti o rẹ labẹ igi ni ọsan. Wọn jẹ alejo ninu ile eniyan. Wọn ti ṣiṣẹ bi atọna fun arinrinajo ti ilẹ ṣu ba. Pẹlu ọwọ ara wọn, wọn tan ina sori pẹpẹ. Wọn ṣi ilẹkun ile tubu wọn si tu awọn iranṣẹ Oluwa silẹ. Wọn wọ aṣọ ọrun, wọn wa lati yi okuta kuro lori iboji Olugbala.

Ni irisi eniyan awọn angẹli saba maa n wa ninu apejọpọ awọn olododo, wọn si n ṣe ibẹwo si apejọpọ awọn ẹni buburu gẹgẹ bi wọn ti lọ si Sodomu, lati ṣe akọsilẹ iṣẹ wọn, lati mọ boya wọn ti la aala ifarada Ọlọrun kọja. Oluwa ni inu didun ninu aanu, nitori awọn perete ti wọn n sin In nitootọ, O fa ọwọ ijamba sẹyin, O si jẹ ki akoko alaafia awọn eniyan Rẹ o pọ si. Oye awọn ti n ṣẹ si Ọlọrun ko to nnkan rara wipe awọn olootọ perete ti wọn fẹran lati gan ati lati jẹ niya ni wọn n da ẹmi awọn funra wọn si.

Bi o tilẹ jẹ wipe awọn alaṣẹ aye yii ko mọ, sibẹ ni ọpọ igba níbi apero wọn, awọn angẹli n sọrọ nibẹ. Oju eniyan n wo wọn, eti eniyan n gbọ ipẹ wọn, ete eniyan ti tako àbá wọn ti o si kẹgan imọran wọn, ọwọ eniyan ba wọn pẹlu eebu ati abuku. Ninu gbọngan apero ati ile idajọ, awọn iranṣẹ ọrun wọnyi ti fihan wipe

awọn ni oye kikun nipa itan eniyan, wọn ti fi ara wọn han wipe wọn le gbeja awọn ti a n fiya jẹ ju awọn olugbeja ti ẹnu wọn yọ julọ. Wọn ti ba erongba jẹ wọn si ti dawọ ibi duro, eyi ti i ba dawọ iṣẹ Ọlọrun duro ni ọna ti o ga, ti i ba tun fa ijiya fun awọn eniyan Rẹ. Ni akoko wahala ati idamu, "angẹli Oluwa yi awọn ti wọn bẹru Rẹ ka, o si gba wọn." O. Dafidi 34:7.

Pẹlu ifẹ ọkan gbigbona, awọn eniyan Ọlọrun duro de ami Ọba wọn ti n bọ. Bi a ba ti n beere lọwọ aṣọna, "Bawo ni alẹ ti ri?" idahun naa laiṣeyemeji ni wipe, "'Owurọ n bọ ati aṣalẹ pẹlu.'" Aisaya 21:11, 12. Imọlẹ n tan ninu awọsanma lori awọn oke. Laipẹ a o fi ogo Rẹ han. Oorun ododo yoo tan jade laipẹ. Owurọ ati aṣalẹ jumọ ku si dẹdẹ—ibẹrẹ ọjọ ailopin fun awọn olododo, ati ikorajọ aṣalẹ ailopin fun awọn eniyan buburu.

Bi awọn ti n jijadu ti n gbe ẹbẹ wọn wa siwaju Ọlọrun, aṣọ iboju ti o ya wọn ya aye airi fẹrẹ ẹ ka kuro. Awọn ọrun tan pẹlu yiyọ ọjọ ailopin, ati bi ìró orin awọn angẹli, ọrọ naa wa sinu eti wọn: "Ẹ duro ṣinṣin ninu igbọran yin. Iranlọwọ n bọ." Kristi Aṣẹgun alagbara, na ade ologo ainipẹkun si awọn ọmọ ogun Rẹ ti aarẹ mu, ohùn Rẹ si jade wa lati inu ilẹkun ti a rọra ṣi silẹ: "Kiyẹsi, Emi wa pẹlu yin. Ẹ maṣe bẹru. Emi mọ gbogbo ibanujẹ yin; Mo ti ko ẹdun yin. Ki i ṣe ọta ti a koi ti i danwo ni ẹni ti ẹyin n ba jagun. Mo ti ja ija naa fun yin, ni orukọ Mi, ẹ ju aṣẹgun lọ."

Olugbala ọwọn yoo ran iranlọwọ lọgan ti a ba nilo rẹ. A ya ọna ọrun si mimọ pẹlu ipa ẹṣẹ Rẹ. Gbogbo ẹgun ti o gun wa lẹṣẹ ti gun ẹṣẹ Rẹ. Gbogbo agbelebu ti a pe wa lati gbe ni O ti gbe fun wa. Oluwa faaye gba idamu, lati pese ọkan silẹ fun alaafia. Akoko idamu jẹ akoko inira ẹlẹru fun awọn eniyan Ọlọrun; ṣugbọn o jẹ akoko ti o yẹ ki gbogbo onigbagbọ tootọ wọna fun, pẹlu igbagbọ o le ri ki oṣumare ileri o yi ọ ka.

"Awọn ẹni irapada Oluwa yoo pada, wọn yoo wa si Sioni pẹlu orin; ayọ ainipẹkun yoo wa ni ori wọn: wọn yoo ri idunnu ati ayọ gba; ikaanu ati ọfọ yoo fo lọ. Emi ani Emi ni Ẹni ti n tu yin ninu: tani iwọ ti iwọ yoo fi bẹru eniyan ti yoo ku, ati ọmọ eniyan ti a o ṣe bi koriko; ti iwọ si gbagbe Oluwa Ẹlẹda rẹ; . . . ti iwọ si n bẹru nigba gbogbo lojojumọ nitori irunu aninilara, bi ẹnipe o ṣetan lati parun? nibo ni irunu aninilara naa ha gbe wa? Onde ti a ti ṣi nipo yara ki a baa le tu silẹ, ati ki o ma baa ku sinu iho, tabi ki onjẹ rẹ ma baa tan. Ṣugbọn Emi ni Oluwa Ọlọrun rẹ, ti o pin okun niya, eyi ti igbi rẹ n ho: Oluwa awọn ọmọ ogun ni orukọ Rẹ. Emi si ti fi ọrọ Mi si ẹnu rẹ, Mo si ti fi ojiji ọwọ mi daabo bo ọ." Aisaya 51:11—16.

"Nitori naa gbọ eyi na, iwọ ẹni ti a n pọn loju, ti o si mu amuyo, ṣugbọn ki i ṣe nipa waini: Bayi ni Oluwa rẹ Jehofa wi, ati Ọlọrun rẹ

ti n gbeja eniyan Rẹ, Kiyesi, Emi ti gba ago iwariri kuro ni ọwọ rẹ, gẹdẹgẹdẹ ago irunu Mi; iwọ ki yoo si mu u mọ; ṣugbọn Emi yoo si fi si ọwọ awọn ti n pọn ọ loju; ti wọn ti wi fun ọkan rẹ pe, Wolẹ ki a ba le rekọja: ti iwọ si tẹ ara rẹ silẹ bi ilẹ, ati bi popo fun awọn ti wọn rekọja." Ẹsẹ 21—23.

Oju Ọlọrun n wò de ọjọ iwaju, o n wo wahala ti awọn eniyan Rẹ yoo pade nigba ti agbara aye yoo doju kọ wọn. Bi onde ti a ṣi nipo, wọn a wa ninu ibẹru iku nitori ebi tabi iwa ipa. Ṣugbọn Ẹni Mimọ ti O pin Okun Pupa niya niwaju Israeli, yoo fi agbara nla Rẹ han, yoo si yi igbekun wọn pada. "Wọn yoo jẹ temi, ni Oluwa awọn ọmọ ogun wi, ni ọjọ naa ti Emi yoo ko ohun ọṣọ Mi jọ; Emi yoo da wọn si, bi eniyan ti n da ọmọ rẹ ti o n sin in si." Malaki 3:17. Bi a ba ta ẹjẹ awọn ẹlẹri ododo Kristi silẹ ni akoko yii, ko ni jẹ eso ti a gbin lati mu ikore wa fun Ọlọrun, bi ẹjẹ awọn ajẹriku. Iṣegbọran wọn ko ni jẹ ẹri lati mu ki awọn miran o gbagbọ ninu otitọ; nitori awọn alaya lile ti bi igbi aanu sẹyin titi ti ko fi le wa mọ. Bi a ba wa fi awọn olododo silẹ lati ṣubu bi ẹran ije ni ọwọ awọn ọta wọn, yoo jẹ iṣẹgun fun ọmọ alade okunkun. Onisaamu naa sọ pe: "Ni akoko iyọnu yoo pa mi mọ ninu ibi aabo Rẹ: nibi ikọkọ ile Rẹ ni yoo pa mi mọ si." O. Dafidi 27:5. Kristi ti sọrọ: "Ẹ wa ẹyin eniyan Mi, ẹ wọ inu iyẹwu yin lọ, ki ẹ si ti ilẹkun mọ ara yin: ẹ fi ara yin pamọ fun igba diẹ, titi ti ibinu yoo fi kọja. Nitori, kiyesi, Oluwa wá lati ibugbe Rẹ wa lati jẹ awọn olugbe aye niya fun aiṣedeede wọn." Aisaya 26:20, 21. Igbasilẹ awọn ti wọn ti fi suuru duro de wiwa Rẹ ti a si ti kọ orukọ wọn sinu iwe iye yoo jẹ eyi ti o logo.

40

A Gba Awọn Eniyan Ọlọrun Silẹ

Nigba ti a ba mu aabo ofin eniyan kuro lọdọ awọn ti wọn bọwọ fun ofin Ọlọrun, orisirisi ẹgbẹ ni yoo dide ni orisirisi orilẹ ede ti yoo pe fun iparun wọn. Bi akoko ti a ṣe ninu ofin ti n sunmọle, awọn eniyan yoo gbimọ pọ lati fa awọn ẹgbẹ ti a korira yii tu. A yoo pinu lati ṣe ikọlu gboogi ni aṣalẹ kan, eyi ti yoo pa ohun iyapa ti n ṣe ibawi yii lẹnumọ patapata.

Awọn eniyan Ọlọrun—awọn miran ninu ọgba ẹwọn, awọn miran fi ara pamọ nibi kọlọfin ninu igbo ati ni awọn oke—ṣi n bẹbẹ fun aabo Ọlọrun, nigba ti ẹgbẹ awọn ti o dihamọra wa ni ibi gbogbo, ti awọn angẹli eṣu n ti siwaju, n mura silẹ fun iṣẹ iku. Bayi ni akoko ti ohun gbogbo de gongo ni Ọlọrun Israeli yoo ṣiṣẹ fun igbala awọn ayanfẹ Rẹ. Oluwa wipe: "Ẹyin yoo ni orin kan gẹgẹ bi igba ti a n ṣe ajọ ni oru, ati inudidun, gẹgẹ bi igba ti eniyan n lọ . . . lati wa si oke Oluwa, si Alagbara Nla Israeli.

Oluwa yoo si jẹ ki a gbọ ohùn ologo Rẹ, yoo si fi isọkalẹ apa Rẹ han pẹlu irunu ibinu Rẹ, ati pẹlu ọwọ ina ajonirun, pẹlu ifọnka, iji, ati yinyin." Aisaya 30:29, 30.

Pẹlu iro iṣẹgun, ifinisẹsin ati egun, ọgọọrọ awọn eniyan buburu fẹ kọlu awọn ti wọn wa ni ikawọ wọn, nigba ti okunkun dudu, ti o dudu ju okunkun alẹ lọ ṣubu sori ilẹ aye. Lẹyin eyi, oṣumare, ti o n tan pẹlu ogo lati itẹ Ọlọrun, la ọrun ja ti o si dabi ẹnipe o yi awọn ẹgbẹ ti n gbadura ka. Awọn ero ti n binu duro lọgan. Ariwo ẹgan wọn dakẹ. Wọn gbagbe awọn ti wọn n binu apaniyan si. Pẹlu ibẹru, wọn wo ami majẹmu Ọlọrun, wọn si fẹ lati ni aabo kuro lọwọ itansan agbara rẹ.

Awọn eniyan Ọlọrun gbọ ọrọ ti o ja geere ti o dabi orin wipe “Gbe oju soke,” ni gbigbe oju soke si ọrun, wọn ri oṣumare ileri. Ikuuku ibinu dudu ti o bo ofurufu fi aaye silẹ, bii Stefanu, wọn tẹ oju mọ ọrun, wọn si ri ogo Ọlọrun ti Ọmọ eniyan si joko lori itẹ Rẹ. Ni iri Rẹ ni Ọlọrun wọn ri ami irẹsilẹ Rẹ; lati ètè Rẹ wa wọn gbọ ibeere ti a beere niwaju Baba Rẹ ati awọn angẹli mimọ: “Emi fẹ ki awọn pẹlu, ti Iwọ ti fi fun Mi o wa pẹlu Mi nibi ti Emi gbe wa.” Johanu 17:24. Lẹẹkansi a gbọ ohun iṣẹgun bi iro orin ti n wipe: “Wọn wa! wọn wa! ni mimọ, ni ailewu ati ni ailabawọn. Wọn ti pa ọrọ suuru Mi mọ, wọn yoo rin laarin awọn angẹli;” ètè jijoro ti n gbọn ti awọn ti wọn duro ṣinṣin ninu igbagbọ si kigbe iṣẹgun.

Ni oruganjọ ni Ọlọrun fi agbara Rẹ han fun idasilẹ awọn eniyan Rẹ. Iṣẹ ami ati iṣẹ iyanu n ṣẹlẹ ni ṣiṣe n tẹle. Awọn ẹni ibi n wo iṣẹlẹ naa pẹlu ẹru ati iyanu, nigba ti awọn olododo n wo ami idasilẹ wọn pẹlu ayọ mimọ. O dabi ẹnipe gbogbo iṣẹda ya kuro ni ọna wọn. Iṣan omi ṣiwọ ṣiṣan. Ikuuku dudu n parapọ wọn si n kọlu ara wọn. Ni aarin ofurufu ti n binu, alafo kan wa ti o ni ogo ti a ko le fẹnu sọ, nibi ti ohùn Ọlọrun ti jade wa bi ìró ohùn ọpọ omi ti n wipe: “O pari.” Ifihan 16:17.

Ohùn naa mi ọrun ati aye. Ilẹ ríri ti o lagbara ṣẹlẹ, “iru eyi ti koi ti i si ri lati igba ti eniyan ti wa ni ori ilẹ aye, ilẹ riri naa lagbara o si pọ jọjọ.” Ẹsẹ 17, 18. O dabi ẹnipe ofurufu ṣi silẹ, o tun pade. Ogo lati itẹ Ọlọrun si tan jade wa. Awọn oke mì bii koriro ninu afẹfẹ, awọn apata si fọn kaakiri ilẹ. A gbọ ìró ìjì ti n bọ. Okun ru fun ibinu. A gbọ igbe ẹfufu lile bi ìró ohùn awọn ẹmi aimọ ti n lọ ṣe iṣẹ iparun. Gbogbo ilẹ aye mi, o si ru bi igbi omi okun. Ilẹ ya. O dabi ẹnipe ipilẹ rẹ n ṣubu. Awọn oke n tẹri. Awọn erekuṣu ti a n gbé poora. Awọn ibudokọ ọkọ oju omi ti wọn dabi Sodomu nitori iwa ibi tẹri wọ inu omi ti n binu. Babiloni nla naa wa si iranti niwaju Ọlọrun, “lati fun ni ago waini irunu ibinu Rẹ.” Awọn yinyin nla, ti wọn to bi “iwọn talẹnti kan” n ṣe iṣẹ iparun wọn. Ẹsẹ 19, 21. Awọn ilu agberaga di pẹtẹlẹ. Awọn aafin nla, nibi ti awọn eniyan nla aye fi ọrọ wọn ṣe ọṣọ si lati fi ogo fun ara wọn n wó lulẹ nisoju wọn. Awọn ogiri ọgba ẹwọn ya lulẹ ti a si tu awọn eniyan Ọlọrun, ti a mu nigbekun nitori igbagbọ wọn silẹ.

Awọn iboji ṣi silẹ, “ọpọ awọn ti wọn sun sinu erupẹ ilẹ . . . ji dide, awọn kan si iye ainipẹkun, ati awọn kan si itiju ati ẹgan ayeraye.” Danieli 12:2. Gbogbo awọn ti wọn kú ninu igbagbọ iṣẹ iranṣẹ angẹli kẹta jade lati inu iboji pẹlu ara ti a ṣe logo, lati gbọ majẹmu alaafia ti Ọlọrun da pẹlu awọn ti wọn pa ofin Rẹ mọ. “Awọn pẹlu ti wọn gun ni ọkọ” (Ifihan 1:7), awọn ti wọn fi Kristi ṣẹsin ti wọn kẹgan Rẹ nigba ti O n ku ninu irora, ati awọn ti wọn fi ipa ṣe atako si otitọ Rẹ ati awọn

eniyan Rẹ julọ, ni a ji dide lati ri ninu ogo Rẹ ati lati ri ọla ti a bu fun awọn olootọ ati olugbọran. Ikuuku nla bo oju awọsanma; sibẹ, oorun ntan sihinsọhun, o fi ara han bi oju igbẹsan Jehofa. Mọnamọna nla n kọ ni oju ọrun, wọn yi aye po pẹlu ọwọ ina. Loke awọn iro ara naa, awọn ohùn ẹlẹru n kede iparun awọn eniyan buburu. Ki i ṣe gbogbo eniyan ni wọn ni oye ohun ti wọn n sọ, ṣugbọn awọn ẹlẹkọ eke gbọ yekeyeke. Awọn ti wọn jẹ alaibikita, afọnnu, ati olugbejakoni, ti wọn n yọ ninu iwa ika si awọn eniyan ti n pa ofin Ọlọrun mọ, laipẹ yii, wa kun fun idamu ati iwariri ninu ibẹru. Iro igbe wọn kọja ohùn afẹfẹ. Awọn ẹmi aimọ gba Kristi ni Ọlọrun, wọn si wariri niwaju Rẹ, nigba ti awọn eniyan n bẹbẹ fun aanu ti wọn si n rakoro nitori ibẹru.

Awọn woli igbaani sọ bi wọn ti n woye ọjọ Oluwa ninu iran mimọ wipe: “Ẹ hu; nitori ọjọ Oluwa ku si dẹdẹ; yoo de bi iparun lati ọdọ Alagbara wa.” Aisaya 13:6. “Ẹ wọ inu apata lọ, e fi ara pamọ sinu erupẹ fun ẹru nitori ibẹru Oluwa, ati nitori ọjọ ogo ọla nla Rẹ. A o rẹ ìwò giga eniyan silẹ, a o si tẹ ori agberaga eniyan ba, Oluwa nikanṣoṣo ni a o gbe ga ni ọjọ naa. Nitori ọjọ Oluwa awọn ọmọ ogun yoo wa lori olukuluku ẹni ti o rera, ti o si gberaga, ati lori olukuluku ẹni ti a gbe soke, oun ni a o rẹ silẹ.” “Ni ọjọ naa eniyan yoo ju orisa fadaka, orisa wura rẹ, ti wọn ṣe olukuluku wọn funra wọn lati maa bọ, si ekute ati si adan; lati lọ sinu palapala apata, ati si oke apata sísán nitori ibẹru Oluwa, ati nitori ogo ọlanla Rẹ, nigba ti O ba dide lati mi ilẹ aye jigijigi.” Aisaya 2: 10—12, 20, 21.

Laarin apala kan ninu ofurufu, irawọ kan n tan eyi ti itansan rẹ tan ni ilopo mẹrin ni afiwe pẹlu okunkun naa. O sọrọ ireti ati ayọ si awọn olootọ, ṣugbọn onroro ati ibinu si awọn ti wọn n ru ofin Ọlọrun. Awọn ti wọn fi ohun gbogbo silẹ nitori Kristi wa ninu aabo Kristi nisinsinyii, a pawọn mọ sinu ibi kọlọfin ogo Ọlọrun. A ti dan wọn wo niwaju araye ati awọn ti wọn gan otitọ, wọn si ti fi igboran wọn han si Ẹni ti O ku fun wọn. Iyatọ ti o yanilẹnu de sori awọn ti wọn duro ṣinṣin ni oju iku. Lojiji a gba wọn silẹ kuro lọwọ okunkun ati iwa onroro nla awọn eniyan ti a sọ di ẹmi aimọ. Oju wọn ti o joro, ti o kun fun aniyan ti o si rù laipẹ yii wa n dan pẹlu iyanu, igbagbọ ati ifẹ. Ohun wọn dide ninu orin iṣẹgun: “Ọlọrun ni aabo ati agbara wa, lọwọ lọwọ iranlọwọ ni igba ipọnju. Nitori naa a ki yoo bẹru bi a tilẹ ṣi aye ni idi, ti a si ṣi awọn oke nla nipo lọ si inu okun; bi omi rẹ tilẹ n hó ti o si n ru, bi awọn oke tilẹ n mì nipa ọwọ bíbì rẹ.” O. Dafidi 46:1—3.

Nigba ti awọn ọrọ igbẹkẹle mimọ yii n goke lọ si ọdọ Ọlọrun, ikuuku awọsanma bi seyin, a ri awọn ọrun, eyi ti ogo wọn kọja afẹnusọ ni iyatọ si ofurufu dudu ti n binu ni ẹgbẹ mejeejii. Ogo ilu mimọ naa tan jade lati inu ilẹkun nla ti a rọra ṣi. Ọwọ kan si fi ara han

ni oju ọrun ti o gbe okuta walaa meji ti a dipọ dani. Woli naa wipe: “Awọn ọrun yoo kede ododo Rẹ: nitori Ọlọrun funra Rẹ ni onidajọ.” O. Dafidi 50:6. Ofin mimọ naa, ododo Ọlọrun ti a kede ni Sinai gẹgẹ bi itọna fun gbigbe aye laarin ọwọ ina ati àrá, ni a wa fihan awọn eniyan gẹgẹ bi odiwọn fun idajọ. Ọwọ naa ṣi walaa naa, a ri awọn akọsilẹ Ofin Mẹwa, ti o dabi ẹnipe a fi kalamu ina kọ ọ. Ọrọ naa farahan ketekete debi pe gbogbo eniyan ni wọn le ka a. A ru iranti awọn eniyan soke, okunkun ìgba-ohun-asan-gbọ ati ẹkọ eke fẹ danu kuro ninu ọkan gbogbo, a si fi ọrọ mẹwa Ọlọrun, ti o wa lerefe, ti o si yeni yeke, ti o ni aṣẹ han gbogbo awọn olugbe aye.

Ko ṣe e ṣe lati ṣe alaye ibẹru ati ipaya awọn ti n tẹ ofin mimọ Ọlọrun loju. Oluwa fun wọn ni ofin Rẹ ki wọn le fi ṣe odiwọn iwa wọn ki wọn si mọ ibaku wọn nigba ti anfani si wa fun ironupiwada ati atunṣe; ṣugbọn lati le ri ojurere araye, wọn kọ awọn ilana rẹ silẹ, wọn si n kọ eniyan lati dẹṣẹ. Wọn ti ṣe akitiyan lati fi ipa mu eniyan lati ba ọjọ Isinmi Rẹ jẹ. Bayi ofin naa ti wọn gan wa n da wọn lẹbi. Pẹlu ifarahan ẹlẹru, wọn ri wipe wọn ko ni awawi. Wọn yan ẹni ti wọn yoo ṣe iranṣẹ fun ti wọn yoo si sin. “Nigba naa ni ẹyin o pada, ẹ yoo si mọ iyatọ laarin olododo ati eniyan buburu, laarin ẹni ti o sin Ọlọrun ati eni ti ko sin In.” Malaki 3:18.

Awọn ọta ofin Ọlọrun, lati ori awọn oniwaasu de ọdọ eyi ti o kere julọ laarin wọn, ni oye otitọ ati ojuṣe lọna akọtun. O ti pẹ ju fun wọn lati ri i wipe ọjọ Isinmi ofin kẹrin ni edidi Ọlọrun alaaye. O ti pẹ ju fun wọn lati ri ohun ti ọjọ isinmi eke wọn jẹ nitootọ ati lori ipilẹ oniyanrin ti wọn n kọle le. Wọn ri wipe wọn ti n ba Ọlọrun ja. Awọn ẹlẹko ẹsin ti dari awọn ọkan si iparun nigba ti wọn n sọ wipe wọn n dari wọn si ẹnu ọna Paradise. Ayafi bi o ba di igba ijiyin ikẹyin ni wọn a to mọ bi ojuṣe eniyan nibi iṣẹ mimọ ti tobi to ati bi atubọtan aiṣootọ ti lagbara to. Ni igba ainipẹkun ni a to le mọ bi ọkan kan ṣọṣo ti o sọnu ti loye lori to. Iparun ẹlẹru ni yoo jẹ ti awọn ti Ọlọrun yoo sọ fun wipe: Ẹ kuro lọdọ Mi, ẹyin iranṣẹ buburu. A gbọ ohun Ọlọrun lati ọrun ti o n kede ọjọ ati wakati wiwa Jesu, ti o si n ṣe majẹmu ainipẹkun fun awọn eniyan Rẹ. Bi ìró àrá ti o pariwo julọ, ọrọ Rẹ la aye ja. Israeli Ọlọrun duro, wọn n tẹti silẹ pẹlu oju wọn ti n woke. Ogo Rẹ tan imọlẹ si oju wọn, o n dan bi oju Mose ti ri nigba ti o sọkalẹ ti Sinai wa. Awọn ẹni buburu ko le wo wọn. Nigba ti a kede ibukun si ori awọn ti wọn bu ọla fun Ọlọrun nipa pipa ọjọ Isinmi mọ, a gbọ ariwo nla iṣẹgun.

Laipẹ ikuuku dudu kekere kan farahan ni iha ila oorun, ti o to idaji ọwọ eniyan. Ikuuku yii ni o yi Olugbala ka, eyi ti o farahan loke bi eyi ti okunkun yi ka. Awọn eniyan Ọlọrun mọ wipe eyi jẹ ami Ọmọ eniyan. Ni idakẹjẹ ọlọwọ wọn wo bi o ti n sunmọ aye, ti o n mọlẹ si

ti ogo rẹ si n pọ si, titi ti o fi di ikuuku awọsanma funfun nla, isalẹ rẹ jẹ ogo bi ina ajonirun, ati loke rẹ oṣumare majẹmu. Jesu n gun ẹṣin lọ bi aṣẹgun nla. Nisinsinyii, ki i ṣe "Ọkunrin Onirobinujẹ" lati mu ago kikoro itiju ati iparun, O wa, aṣẹgun ni ọrun ati aye, lati ṣe idajọ alaaye ati oku. "Olododo ati otitọ," "ninu ododo ni O n ṣe idajọ ti o si n jagun." "Awọn ẹgbẹ ogun ọrun" (Ifihan 19:11, 14) si tẹle E. Pẹlu orin ọrun, awọn angẹli mimọ, ti wọn pọ ni iye, ti a ko le ka, ba A kọwọ rin. Ofurufu dabi ẹnipe o kun fun awọn ẹni didan—"ẹgbẹẹgbẹrun lọna ẹgbẹẹgbẹrun, ati ẹgbẹrun lọna ẹgbẹrun." Ko si kalamu eniyan ti o le ṣe alaye iṣẹlẹ naa ko si oye eniyan ti o le ni oye pipe nipa ogo rẹ. "Ogo Rẹ bo awọn ọrun, ilẹ aye si kun fun iyin Rẹ. Itansan Rẹ si dabi imọlẹ." Abakuku 3:3, 4. Bi ikuuku alaaye naa ti n sunmọ, gbogbo oju ri Ọmọ Alade iye. Ko si ade ẹgun ti o ba ori mimọ Rẹ jẹ nisinsinyii, sugbọn ade ogo ni o wa ni ori mimọ Rẹ. Irisi Rẹ tan ju itansan oorun ni ọsan gangan lọ. "O si ni orukọ kan ti a kọ si ara aṣọ Rẹ ati si ori itan Rẹ, Ọba awọn ọba, ati Oluwa awọn oluwa." Ifihan 19:16.

"Gbogbo oju di jijoro" niwaju Rẹ, ibẹru ainireti ainipẹkun bọ lu awọn ti wọn kọ aanu Ọlọrun silẹ. "Ọkan yọ, orokun si kọlu ara wọn, . . . oju awọn ti wọn pejọ si ṣokunkun." Jeremaya 30:6; Nahumu 2:10. Awọn olododo kigbe pẹlu iwariri: "Tani yoo le duro?" Awọn angẹli dakẹ orin, akoko idakẹjẹ ẹlẹru si wa. Nigba naa ni a gbọ ohùn Jesu ti n wipe: "Oore ọfẹ Mi to fun yin." Oju awọn olododo mọlẹ, ayọ si kun gbogbo ọkan. Awọn angẹli gbe ohun wọn soke, wọn kọ orin si bi wọn ti n sunmọ aye.

Ọba awọn ọba ṣokalẹ wa ninu ikuuku awọsanma, ti ọwọ ina tí n jo yii ka. Awọn ọrun ṣi bi iwe, ilẹ aye wa riri niwaju Rẹ, gbogbo oke ati erekuṣu ṣi kuro ni ipo wọn. "Ọlọrun wa yoo wa, ki yoo si dakẹ: ina yoo maa jo niwaju Rẹ, ẹfufu lile yoo maa ja yi I kaakiri. Yoo si ke si awọn ọrun lati oke wa, ati si aye, ki O baa le ṣe idajọ awọn eniyan Rẹ." O. Dafidi 50:3, 4.

"Ati awọn ọba aye, ati awọn eniyan nla, ati awọn ọlọrọ, ati awọn olori ogun, ati awọn alagbara, ati gbogbo onde ati gbogbo ominira, fi ara wọn pamọ sinu iho ilẹ ati ninu apata awọn oke; wọn sọ fun oke ati apata, Wo lu wa, ki o si pawa mọ kuro ni oju Ẹni ti O joko lori itẹ, ati kuro lọwọ ibinu Ọdọ Aguntan naa: nitori ti ọjọ nla ibinu Rẹ de; tani yoo si le duro." Ifihan 6:15—17.

Ifirẹrin ẹlẹya duro. Awọn ete ti n purọ dakẹ jẹẹ. Ikọlura ohun ija ogun, irọkẹkẹ ogun "pẹlu ariwo idarudapọ ati aṣọ ti a yi ninu ẹjẹ" (Aisaya 9:5), duro jẹ. Ko si ohun ti a gbọ mọ ayafi ohun adura ati ariwo ẹkun ati ọfọ. Awọn ti wọn n kẹgan laipẹ yii kigbe wipe: "Ọjọ nla ibinu Rẹ de, tani yoo le duro?" Awọn ẹni buburu gbadura ki a tẹwọnri

sinu apata awọn oke dipo ki wọn pade oju Ẹni ti wọn kẹgan ti wọn si kọ silẹ.

Wọn mọ ohùn naa, ti o wọ eti awọn oku. Ọpọ igba ni ohùn ẹbẹ jẹjẹ naa n pe wọn wa si ironupiwada. Ọpọ igba ni a gbọ ninu ipẹ ọrẹ, arakunrin, Olurapada. Ko si ohùn ti o le kun fun idalẹbi, ti o wuwo nitori ikilọ ni gbangba, si awọn ti wọn kọ oore ọfẹ Rẹ silẹ bi ohùn naa ti o pẹ ti o ti n bẹbẹ wipe: "Ẹ yipada, ẹ yipada kuro ninu ọna buburu yin, nitori eeṣe ti ẹyin yoo fi ku?" Isikiẹli 33:11. Ah i ba jẹ ohùn ajeji! Jesu sọ wipe: "Emi ti pe, ẹyin si kọ; Mo ti na ọwọ Mi sita, ko si si ẹni ti o ka a si; ṣugbọn ẹyin sọ gbogbo imọran Mi di asan, ẹ ki yoo si tẹti si ibawi Mi." Owe 1:24, 25. Ohùn naa sọ iranti ji eyi ti wọn ṣe akitiyan lasan lati parẹ—ikilọ ti a gan, ipe ti a kọ, anfani ti a ko kàsí.

Awọn kan wa ti wọn fi Kristi ṣẹsin ninu irẹsilẹ Rẹ. Pẹlu agbara ti n muni wariri wọn ranti ọrọ Ẹni ti n jiya, nigba ti olu alufa rọ Ọ, O sọ tọwọtọwọ wipe: "Lẹyin eyi, ẹyin yoo ri Ọmọ eniyan ti O joko ni ọwọ ọtun agbara, ti O n bọ ninu ikuuku awọsanma." Matiu 26:64. Bayi wọn ri I ninu ogo Rẹ, wọn ko si tii ri I ki o joko ni ọwọ ọtun agbara.

Awọn ti wọn fi ṣẹsin nitori ti O pe ara Rẹ ni Ọmọ Ọlọrun ko le sọrọ mọ nisinsinyii. Ọba Hẹrọdu agberaga wa nibẹ, ẹni ti o fi ṣẹfẹ nitori oyè ọba Rẹ ti o si sọ fun awọn ọmọ ogun rẹ ti n ṣẹfẹ lati de ni ade ọba. Awọn eniyan ti wọn fi ọwọ àìlọwọ wọ Ọ ni aṣọ ọgbọ wa nibẹ, awọn ti wọn gbe ade ẹgun wọ ori mimọ Rẹ, ti wọn gbe ọpa aṣẹ le ọwọ Rẹ ti ko si janpata, ti wọn si tẹriba niwaju Rẹ ni ifinisẹsin. Awọn ti wọn lu U, ti wọn tutọ si Ọmọ Alalde iye lara wa gbe oju sa kuro ni bi O ti n wo wọn ti wọn si n wa lati sa kuro nibi ogo Rẹ ti n boni mọlẹ. Awọn ti wọn kan ẹsọ mọ ni ọwọ ati ẹsẹ, jagunjagun ti o fi ọkọ gun Un ni ẹgbẹ, kiyesi awọn ami wọnyi pẹlu ẹru ati ibọkanjẹ.

Pẹlu iranti yekeyeke awọn alufa ati alaṣẹ ranti awọn iṣẹlẹ Kalfari. Pẹlu ibẹru wọn ranti bi wọn ti sọ nigba ti wọn n mi ori wọn ni idunnu bi Satani, wipe: "O gba awọn miran la; ko le gba ara Rẹ la. Bi oun ba ni Ọba Isreali, jẹ ki O sọkalẹ wa lati ori agbelebu nisinsinyii, awa yoo si gba A gbọ. O gbẹkẹle Ọlọrun, jẹki O gba A silẹ nisinsinyii, bi yoo ba gba A." Matiu 27:42, 43.

Wọn ranti daradara owe Olugbala nipa awọn oluṣọgba ti wọn kọ lati fun oluwa wọn ni eso ọgba ajara, ti wọn lo awọn iranṣẹ Rẹ nilokulo ti wọn si pa ọmọ rẹ. Wọn ranti pẹlu, ọrọ ti wọn funra wọn sọ: Oluwa ọgba ajara naa "yoo pa awọn ẹni buburu naa run nipakupa." Ninu ẹṣẹ ati ijiya awọn alaiṣootọ naa, awọn alufa ati alagba ri iṣẹ ati iparun ti o tọ si wọn. Bayi wọn kigbe irora iku. Igbe ti o roke ju, "Kan An mọ agbelebu, kan An mọ agbelebu," eyi ti o kun awọn popona Jerusalẹmu ni a gbọ ti n wi pẹlu ibẹru ati ainireti wipe "Oun ni Ọmọ

Ọlọrun! Oun ni Mesaya tootọ!" Wọn wa ọna lati sa kuro niwaju Ọba awọn ọba. Ninu iho ilẹ ti awọn ohun tí a dá ti faya pẹrẹpẹrẹ, wọn tiraka, lasan lati farapamọ.

Ninu igbesi aye awọn ti wọn kọ otitọ silẹ, akoko wa ti ẹri ọkan n ṣiṣẹ, nigba ti wọn ranti igbe aye agabagebe, ti ọkan wọn si jiya nitori abamọ asan. Ṣugbọn kini awọn nnkan wọnyii jasi ni afiwe pẹlu ikaanu ọjọ naa nigbati, "ẹru yoo wa bi isọdahoro," nigbati "iparun yoo wa bi iji lile"! Owe 1:27. Awọn ti i ba pa Kristi ati awọn eniyan olootọ Rẹ wa ri ogo ti o wa lori wọn. Ni aarin ibẹru wọn, wọn gbọ ohun awọn ẹni mimọ pẹlu orin ayọ ti n wi pe: "Kiyesii, Ọlọrun wa niyii; awa ti duro de E, Oun yoo si gba wa." Aisaya 25:9.

Laarin aye ti n mi titi, kikọ mọnamọna, ati ìró àrá, ohùn Ọmọ Ọlọrun pe awọn ẹni mimọ ti wọn sun jade. O wo iboji awọn olododo, nigba naa ni, O gbe ọwọ Rẹ si ọrun, O kigbe wipe: "Ẹ dide, ẹ dide, ẹyin ti ẹ sun ninu erupẹ, ẹ dide soke!" La gbogbo igun ati ibu aye ja awọn oku yoo gbọ ohun naa, awọn ti wọn gbọ yoo si ye. Gbogbo aye kun fun ọpọ eniyan lati gbogbo orilẹ ede ati ẹya ati ede ati eniyan. Wọn jade wa lati inu ile tubu iku, a si gbe ogo ainipẹkun wọ wọn, wọn kigbe wipe: "Iku oro rẹ da? Isa oku, iṣẹgun rẹ da?" 1 Kọrintin 15:55. Awọn olododo ti wọn wa laaye ati awọn ẹni mimọ ti a ji dide pa ohun wọn pọ ni igbe nla ati idunnu iṣẹgun.

Gbogbo wọn jade wa lati inu iboji wọn pẹlu bi wọn ti ga to nigba ti wọn wọ inu iboji. Adamu, ẹni ti o duro laarin awọn ti a ji dide ga o si lọla ni ìrí ati ni giga, diẹ ni Ọmọ Ọlọrun fi ga ju u lọ. O yatọ patapata si awọn eniyan ti wọn wa lẹyin rẹ; ni abala yii kan ṣoṣo a fi ibajẹ nla ti o ba iran yii han. Ṣugbọn gbogbo wọn ni wọn jinde pẹlu awọ tutu ati agbara ayeraye ti ọdọ. Ni ibẹrẹ a da eniyan ni aworan Ọlọrun, ki i ṣe ni iwa nikan bikoṣe ni ìrí ati ìwò oju pẹlu. Ẹṣẹ ba aworan Ọlọrun jẹ, o si fẹrẹ pa a rẹ tan patapata, ṣugbọn Kristi wa lati da aworan Ọlọrun ti a padanu pada. Yoo yi ara kiku wa pada, yoo si ṣe e bi ara ologo Rẹ. Ara kiku ati idibajẹ ti ko ni ẹwa ti ẹṣẹ ti ko abawọn ba nigba kan ri a di pipe, yoo rẹwa, a si wa ni aiku. Gbogbo abawọn ati ibaku ni a fi silẹ ninu iboji. Nigba ti a ba da wọn pada si igi iye ni Edẹni ti wọn ti padanu fun igba pipẹ, awọn ti a ra pada a "dagba soke" (Malaki 4:2) de ìga kikun iran naa ni ogo igba iwaṣẹ. A o mu egun ẹṣẹ ti o kẹyin kuro, awọn olootọ Kristi a si fi ara han ninu "ẹwa Oluwa Ọlọrun wa," ni iyè, ọkan ati ara wọn a fi aworan Oluwa han ni kikun. Ah! irapada iyanu! ti a ti n sọrọ rẹ fun igba pipẹ, ti a ti n reti rẹ fun igba pipẹ, ti a n ronu le lori pẹlu iwọna giga, ṣugbọn ti a ko ni oye kikun nipa rẹ.

A pa awọn olododo ti wọn wa laaye larada "lọgan, ni iṣẹju aaya." A ṣe wọn logo pẹlu ohùn Ọlọrun; bayii a sọ wọn di aiku ati pẹlu awọn

ẹni mimọ ti a ji dide, a gba wọn soke lati lọ pade Oluwa ninu afẹfẹ. Awọn angẹli "ko awọn ayanfẹ Rẹ jọ pọ lati origun mẹrẹẹrin afẹfẹ lati iha ọrun kan si ekeji." Awọn angẹli mimọ gbe awọn ọmọ wẹwẹ lọ si apa iya wọn. Awọn ọrẹ ti iku ti pin niya fun igba pipẹ wa papọ, ti wọn ko si le pinya mọ, pẹlu orin ayọ wọn jijọ goke lọ si Ilu nla Ọlọrun.

Iyẹ wa ni ẹgbẹ mejeeji kẹkẹ ikuuku naa, labẹ rẹ si ni awọn kẹkẹ alaaye wa; bi ọkọ naa ti n lọ soke, awọn kẹkẹ naa n kigbe, "Mimọ, mimọ, mimọ, Oluwa Ọlọrun Alagbara." Awọn ti a rapada si n kigbe, "Halleluya!" bi ọkọ naa ti n lọ si ọna Jerusalẹmu Tuntun.

Ki wọn to wọ Ilu nla Ọlọrun, Olugbala fun awọn atẹle Rẹ ni ohun iranti iṣẹgun, O si fun wọn ni ohun idanimọ bi ọba. Awọn ẹgbẹ ti n dan naa tò ni igun mẹrin ọgbọọgba yi Ọba wọn ka, Ẹni ti O ga soke ju awọn ẹni mimọ ati awọn angẹli lọ, Ẹni ti oju Rẹ n tan si wọn pẹlu ifẹ. Gbogbo ẹgbẹ ogun awọn ti a rapada ti a ko le ka tẹju mọ Ọ, gbogbo oju n wo ogo Ẹni ti a "ba irisi Rẹ jẹ ju ti ẹnikẹni lọ, ati iduro Rẹ ju ti ọmọ eniyan lọ." Pẹlu ọwọ ọtun ara Rẹ, Jesu gbe ade ogo de ori gbogbo awọn aṣẹgun. Olukuluku ni o ni ade ti o ni "orukọ tuntun" rẹ (Ifihan 2:17), ati ọrọ ti a kọ si, "Mimọ si Oluwa." A fun gbogbo wọn ni imọ ọpẹ aṣẹgun ati harpu ti n dan. Nigba naa, bi awọn adari angẹli ti tẹ ohun kan, gbogbo ọwọ lu harpu wọn pẹlu ọgbọn, ti o mu orin kikun, aladun wa. Idunnu ti a ko le fi ẹnu sọ kun gbogbo ọkan, olukuluku si gbe ohùn soke ni imoore pẹlu iyin: "Si Ẹni naa ti O fẹ wa, ti O fọ wa mọ kuro ninu ẹṣẹ wa pẹlu ẹjẹ ara Rẹ, ti O sọ wa di ọba ati alufa si Ọlọrun ati Baba Rẹ; ti Rẹ ni ogo ati agbara ijọba lae ati laelae." Ifihan 1:5, 6.

Ilu Mimọ naa wa niwaju awọn ti a ra pada. Jesu ṣi ilẹkun nla pearli naa gbagada, ti awọn orilẹ ede ti wọn pa otitọ mọ si wọle. Nibẹ wọn ri paradise Ọlọrun, ile Adamu ni igba ti o wa ni ailẹṣẹ. Nigba naa ni ohùn naa, ti o dun ju orinkorin ti o tii wọ inu eti eniyan lọ wipe: "Ijakadi yin pari." "Ẹ wa, ẹyin alabukun Baba Mi, ẹ jogun ijọba ti a ti pese silẹ fun yin lati ipilẹṣẹ aye wa."

Adura Olugbala fun awọn ọmọ ẹyin Rẹ wa wa si imuṣẹ: "Emi fẹ ki awọn pẹlu ti Iwọ ti fi fun Mi o wa pẹlu Mi nibi ti Emi gbe wa." "Ni ailẹgan niwaju ogo Rẹ pẹlu ayọ nla" (Juda 24), Kristi fi awọn ti O fi ẹjẹ Rẹ ra han Baba, O wipe: "Emi niyii ati awọn ọmọ ti Iwọ ti fi fun Mi." "Awọn ti Iwọ fi fun Mi, Emi pa wọn mọ." Ah! iyanu ifẹ irapada! idunnu wakati naa nigba ti Baba ayeraye wo awọn ti a rapada, ti yoo ri aworan Rẹ, a ti le ibajẹ ẹṣẹ kuro, a si mu idiwọ kuro, ti iran eniyan si wa ni ibamu pẹlu Ọlọrun lẹẹkan si.

Pẹlu ifẹ ti a ko le fi ẹnu sọ, Jesu ki awọn olootọ wa sinu ayọ Oluwa wọn. Ayọ Olugbala wa ninu riri ọkan ti a gbala nipa ijiya ati irẹsilẹ Rẹ

ni ijọba ogo. Awọn ti a rapada yoo jẹ alabapin ninu ayọ Rẹ, bi wọn ti n wo awọn ti a jere si ọdọ Kristi nipasẹ adura wọn, iṣẹ wọn, ati ifi-ara-ẹni-rubọ ifẹ wọn laarin awọn alabukun fun. Bi wọn ti to yi itẹ funfun nla naa ka, idunnu ti a ko le royin kun inu ọkan wọn, nigba ti wọn ri awọn ti a jere fun Kristi, ti wọn si ri ti awọn wọnyi jere awọn miran, ati awọn wọnyi awọn miran, ti gbogbo wọn wa ni ibi isinmi, nibẹ lati fi ade wọn lelẹ ni ẹsẹ Kristi ki wọn si yin In titi aye ainipẹkun.

Bi a ti n gba awọn ti a rapada wọle sinu Ilu Ọlọrun, ariwo ayọ ijọsin gba afẹfẹ kan. Awọn Adamu mejeeji fẹ pade. Ọmọ Ọlọrun duro O si na ọwọ Rẹ sita lati gba baba iran wa—ẹda ti O da, ti o ṣẹ si Ẹlẹda rẹ, ti Olugbala si gba ami ikanmọ-agbelebu si ara nitori ẹṣẹ rẹ. Bi Adamu ti ri ami iṣo, ko ṣubu si aya Oluwa rẹ, ṣugbọn ni iṣẹlẹ o wolẹ si ẹsẹ Rẹ, o ke wipe: "Ọdọ Aguntan naa ti a pa ni o yẹ!" Pẹlu iṣe jẹjẹ, Olugbala gbe e dide O ni ki o wo Edẹni lẹẹkan si, ile nibi ti a ti le e jade fun ọjọ pipẹ.

Lẹyin igba ti a le kuro ni Edẹni, igbesi aye Adamu ninu aye kun fun ibanujẹ. Gbogbo ewe ti n ku, gbogbo ohun irubọ, gbogbo ibaje loju ẹda ti o rẹwa, gbogbo abawọn lori iwa mimọ eniyan, jẹ ohun ti n ran leti nipa ẹṣẹ ni akọtun. Irora ibanujẹ rẹ pọ jọjọ bi o ti n wo o ti ẹṣẹ n pọ si, ti a si kẹgan rẹ gẹgẹ bi okunfa ẹṣẹ ni idahun si awọn ikilọ rẹ. Pẹlu suuru onirẹlẹ, o fi ara da ijiya ẹṣẹ fun bi ẹgbẹrun ọdun kan. O yipada kuro ninu ẹṣẹ rẹ tọkantọkan o gbẹkẹle oore ọfẹ Olugbala, o si ku ninu ireti ajinde. Ọmọ Ọlọrun ra ibaku ati iṣubu eniyan pada, bayii, nipasẹ iṣẹ iwẹnumọ ẹṣẹ, a da Adamu pada sinu iṣakoso rẹ akọkọ.

Ayọ kun inu rẹ, bi o ti n wo awọn igi ti wọn jẹ idunnu rẹ nigba kan ri—awọn igi ti oun funra rẹ ko eso wọn jọ ni igba ailẹṣẹ ati ayọ rẹ. O ri awọn ẹka ti ọwọ ara rẹ tun ṣe, awọn ododo ti oun fi igba kan fẹran lati boju to. Iye rẹ mọ wipe otitọ ni iṣẹlẹ naa; o mọ wipe Edẹni ni a mu bọ sipo nitootọ, ṣugbọn ti o dara ju igba ti a le kuro ninu rẹ lọ. Olugbala mu lọ si ibi igi iye, O si ja eso ologo rẹ, O ni ki o jẹ ẹ. O wo ayika rẹ, o ri ọgọọrọ awọn idile rẹ ti a ra pada, ti wọn duro ni Paradise Ọlọrun. Nigba naa, o fi ade didan rẹ lelẹ lẹsẹ Jesu, o ṣubu si aya Rẹ, o dimọ Olurapada. O lu harpu wura rẹ, awọn orule ọrun si ho pẹlu orin iṣẹgun: "Ọdọ Aguntan naa yẹ, O yẹ, ti a pa ti O tun wa laaye lẹẹkan si." Awọn idile Adamu gbe orin naa wọn si fi ade wọn lelẹ lẹsẹ Kristi bi wọn ti tẹriba niwaju Rẹ ni ijọsin.

Awọn angẹli ti wọn sọkun nigba ti Adamu ṣubu, ti wọn yọ nigba ti Jesu goke re ọrun lẹyin ajinde Rẹ, ti wọn ṣi iboji silẹ fun awọn ti yoo gbagbọ ninu orukọ Rẹ, ri ipade lẹẹkansi naa. Bayii wọn ri wipe iṣẹ irapada ti pari, wọn pa ohun wọn pọ ninu orin iyin.

Lori okun mimọ gaara niwaju itẹ naa, okun digi naa à fi bi eyi ti o dapọ mọ ina,—o n dan jọjọ fun ogo Ọlọrun,—ni awọn ẹgbẹ ti wọn ti “ni iṣẹgun lori ẹranko naa, ati lori aworan rẹ, ati lori ami rẹ, ati lori iye orukọ rẹ” duro si. Pẹlu Ọdọ Aguntan naa lori Oke Sioni,” ti Oun ti duru Ọlọrun,” awọn 144,000 ti a ra pada laarin awọn eniyan duro, a si gbọ bi iro ohun ọpọ omi, ati bi iro àrá nla, “ohùn duru awọn aluduru pẹlu duru wọn.” Wọn si kọ “orin tuntun” niwaju itẹ naa, orin ti ẹnikẹni ko le mọ ayafi awọn 144,000 ni wọn le kọ orin naa nitori orin iriri wọn ni—iriri ti ẹgbẹ kankan ko ni ri. “Awọn wọnyi ni wọn n tẹle Ọdọ Aguntan naa nibikibi ti O n lọ.” Awọn wọnyi ni a ra pada lati inu aye wa, lati aarin awọn alaaye, a ri wọn gẹgẹ bi “akọso eso si Ọlọrun ati si Ọdọ Aguntan.” Ifihan 15:2, 3;14:1—5. “Awọn wọnyi ni wọn jade lati inu idanwo nla wa;” wọn la akoko idamu, ti iru rẹ koi tii si ri lati igba ti awọn orilẹ ede ti wa kọja, wọn fi orí ti iporuuru akoko idamu Jakọbu, wọn ti duro laisi olubalaja titi ti Ọlọrun fi tu idajọ ikẹyin sita. Ṣugbọn a ti da wọn nide, nitori wọn ti “fọ aṣọ wọn, wọn ti sọ ọ di funfun ninu ẹjẹ Ọdọ Aguntan.” “Ko si eke ni ẹnu wọn: nitori ti wọn wa ni ailabuku” niwaju Ọlọrun. “Nitori naa wọn wa niwaju itẹ Ọlọrun, wọn si n sin In ni ọsan ni oru ninu tẹmpili Rẹ: Ẹni ti O joko lori itẹ naa yoo si maa gbe ni aarin wọn.” Wọn ti ri i ti iyan ati ajakalẹ arun pa aye run, ti oorun ni agbara lati jo awọn eniyan pẹlu ooru nla, ti awọn pẹlu fi ara da ijiya ebi ati oungbẹ. Ṣugbọn “ebi ki yoo pa wọn mọ bẹẹ ni ongbẹ ki yoo gbẹ wọn mọ, bẹẹ ni oorun ki yoo tan sori wọn, tabi ooru kankan. Nitori Ọdọ Aguntan naa ti O wa laarin itẹ naa yoo bọ wọn, yoo si mu wọn lọ si ibi orisun omi iye: Ọlọrun yoo si nu omije gbogbo nu kuro ni oju wọn.” Ifihan 7:14—17.

Ni igba gbogbo a maa n kọ awọn ayanfẹ Olugbala lẹkọ, ti wọn si n gba ilana ati ẹkọ ni ile ẹkọ idanwo. Wọn rin ni ọna tooro lori ilẹ aye, a fọ wọn mọ ninu ina ipọnju. Nitori Jesu wọn fi ara da atako, ikorira, ibalorukọjẹ. Wọn tẹle E gba wahala gbigbona kọja, won fi ara da iṣẹra-ẹni, wọn si ni iriri ijakulẹ kikoro. Nipa iriri kikoro ara wọn, wọn mọ bi ẹṣẹ ti buru to, agbara rẹ, ẹbi rẹ, ati iparun rẹ, wọn si n fi ikorira wo o. Oye ẹbọ ayeraye ti a ṣe lati wo o san rẹ wọn silẹ ni oju ara wọn, o si fi ọpẹ ati iyin kun inu wọn eyi ti awọn ti ko ṣubu ri ko le mọ riri rẹ. Wọn fẹran pupọ nitori ti a ti dari ohun ti o pọ ji wọn. Nigba ti wọn ti jẹ alabapin ninu ijiya Kristi, a mu wọn peye lati jẹ alabapin pẹlu Rẹ ninu ogo Rẹ.

Awọn ajogun Ọlọrun wa lati inu yàrá ti ko funni ni irọrun, ile talaka, lati inu tubu, lati inu aṣalẹ, lati inu iho inu ilẹ, lati inu iho ilẹ nla lẹgbẹ okun. Lori ilẹ aye wọn jẹ “alaini, ẹni ti a n pọn loju, ẹni ti a n jẹ niya.” Ọpọlọpọ ni wọn lọ sinu iboji pẹlu ẹgan nitori ti wọn fi iduro

ṣinṣin kọ lati gba itanjẹ Satani. Ile idajọ eniyan pe wọn ni ọdaran to buru julọ. Ṣugbọn nisinsinyii, “Ọlọrun funra Rẹ ni adajọ.” O. Dafidi 50:6. Bayii a yi ipinu aye pada. “O ko ibawi awọn eniyan Rẹ lọ.” Aisaya 25:8. “A yoo pe wọn ni Eniyan mimọ, Ẹni irapada Oluwa.” O ti pese “lati fun wọn ni ẹwa dipo eeru, ororo ayọ dipo ọfọ, aṣọ iyin dipo ẹmi ibanujẹ.” Aisaya 62:12; 61:3. Wọn ki i ṣe alaarẹ, ti a n pọn loju, ti a fọn kaakiri, ti a si n fiya jẹ mọ. Wọn yoo wa pẹlu Oluwa titi lae. Wọn duro niwaju itẹ naa, wọn wọ aṣọ ti o niye lori ju eyi ti ẹnikẹni ti a bu ọla fun julọ ninu aye wọ ri. Wọn de ade ti o logo ju eyi ti ọba aye kankan de ri lọ. Ọjọ irora ati ẹkun dopin titi lae. Ọba ogo ti nu omije nu kuro ninu oju gbogbo, gbogbo okunfa fun ibanujẹ ni a mu kuro. Bi wọn ti n mi imọ ọpe wọn, wọn kọ orin iyin, ti o dun ketekete ti o dun ti o si wa nisọkan; gbogbo ohun gbe orin naa titi ti orin naa fi n ró ni gbogbo orule ọrun: “Ti Ọlọrun wa ti O joko lori itẹ ati ti Ọdọ Aguntan ni igbala.” Gbogbo awọn olugbe ọrun si dahun si iyin naa: “Amin: Ibukun, ati ogo ati ọgbọn, ati ọpẹ, ati iyin, ati agbara, ati ipa ni fun Ọlọrun wa titi lae lae.” Ifihan 7:10, 12.

A tilẹ le bẹrẹ sii ni oye koko ọrọ iyanu irapada ninu aye yii ni. Pẹlu oye kekere wa a le fi tọkantọkan ronu lori itiju ati ogo, iye ati iku, idajọ ati aanu, ti wọn pade lori agbelebu, sibẹ pẹlu ironu wa ti o ga julọ, a ko le ni oye kikun nipa itumọ rẹ. Oye wa nipa iwọn ati ibu, jinjin ati giga, ifẹ irapada ko le mọlẹ to. A ko le ni oye eto irapada tan patapata, ani nigbati awọn ti a ti rapada ba ri bi a ti ri wọn, ti wọn si mọ bi a ti mọ wọn; ṣugbọn titi ayeraye otitọ tuntun yoo maa fi ara han si oye ti o kun fun aanu, ti o si ni idunnu. Bi o tilẹ jẹ wipe ibanujẹ ati irora ati idanwo inu aye ti pari ti a si ti mu ohun ti n ṣe okunfa wọn kuro, awọn eniyan Ọlọrun, titi lae, yoo ni imọ ati oye ohun ti igbala wọn ná ni.

Agbelebu Kristi yoo jẹ imọ ati orin awọn ti a rapada titi aye ainipẹkun. Ninu Kristi ti a ṣe logo, wọn a ri Kristi ti a kan mọ agbelebu. Wọn ko ni gbagbe lae, wipe Ẹni ti agbara Rẹ da, ti O si n ṣe itọju awọn aye ti a ko le ka ninu oju ọrun ti o lọ ṣasu, Ayanfẹ Ọlọrun, Ọlanla ọrun, Ẹni ti awọn kerubu ati serafu didan ni inu didun si lati jọsin fun—rẹ ara Rẹ silẹ lati gbe eniyan ti o ṣubu soke; wipe O gbe ẹbi ati itiju ẹṣẹ, ati ifipamọ oju Baba Rẹ, titi ti iparun aye ti o sọnu fi ba A lọkan jẹ ti o si gba ẹmi Rẹ lori agbelebu Kalfari. Ẹlẹda gbogbo awọn aye, Ẹni ti n dari gbogbo atubọtan, le fi ogo Rẹ silẹ ki O si rẹ ara Rẹ silẹ nitori ifẹ fun eniyan yoo maa ru iyanu ati ijọsin gbogbo agbaala aye soke titi lae. Bi awọn orilẹ ede ti a gbala ba ṣe n wo Olurapada wọn, ti wọn si n ri ogo ainipẹkun Baba ti n tan lara Rẹ, bi wọn ti n wo itẹ naa, eyi ti o wa lati irandiran, ti wọn si mọ wipe ijọba Rẹ ki yoo

lopin, wọn bu jade ninu orin ayọ: “Ọdọ Aguntan naa ti a pa yẹ, O yẹ! ti O fi ẹjẹ ara Rẹ ra wa pada si Ọlọrun.”

Ijinlẹ agbelebu ṣe alaye gbogbo ohun ijinlẹ miran. Ninu imọlẹ ti n tan lati Kalfari awọn iwa Ọlọrun ti wọn n fi ipaya ati ibẹru kun inu wa a wa rẹwa si a si wuni. Aanu, iṣe jẹjẹ, ifẹ obi ni a ri ti o dapọ mọ iwa mimọ, iṣotitọ ati agbara. Nigba ti a ba ri ọlanla itẹ Rẹ, ti o ga, ti a gbe soke, ti a ri iwa Rẹ ni ifarahan pẹlu oore ọfẹ, a yoo ni oye ju bi a ti ni tẹlẹ ri lọ, nipa itumọ oyè ọwọn ni, “Baba wa.”

A o ri wipe Ẹni ti ọgbọn Rẹ ko lopin ko le wa ọna miran fun igbala ju ki O fi Ọmọ Rẹ rubọ. Èrè ti O ri fun irubọ yii ni ayọ wipe aye kun fun awọn eniyan ti a rapada, ti wọn jẹ mimọ, alayọ ti wọn ko si le kú. Abayọri ijakadi Olugbala pẹlu agbara okunkun jẹ ayọ fun awọn ti a ra pada ti o n ró pada si ogo Ọlọrun titi aye ainipẹkun. Bẹẹ gẹgẹ ni ọkan niye lori to ti oye ti a san tẹ Baba lọrun; ti Kristi funra Rẹ, ni itẹlọrun nigba ti O ri eso irubọ nla Rẹ.

41

Ile Aye Di Ahoro

"Ani awọn ẹṣẹ rẹ ti ga de ọrun, Ọlọrun si ti ranti awọn aiṣedeede rẹ. . . . Ẹ kún ago ti o ti kún, ẹ kun fun ni ilọpo meji. Niwọn bi o ti yin ara rẹ logo to, ti o si gbe igbe aye adun, niwọn bẹẹ ni ki ẹ daa loro ki ẹ si fun ni ibanujẹ: nitori ti o wi ni ọkan rẹ pe, Mo joko bi ọbabinrin, emi ki i si i ṣe opó, emi ki yoo si ri ibanujẹ lae. Nitori naa ni ijọ kan ni iyọnu rẹ yoo de, iku ati ibanujẹ ati iyan; a o si fi ina sun un patapata: nitori pe alagbara ni Oluwa Ọlọrun ti n ṣe idajọ rẹ. Awọn ọba aye, ti wọn n ba ṣe agbere, ti wọn si n gbe igbesi aye adun pẹlu rẹ yoo ṣọfọ, wọn yoo si pohun rere ẹkun le lori . . . wọn o maa wipe, o ṣe, o ṣe fun ilu nla naa, Babiloni, ilu alagbara nì! nitori ni wakati kan ni idajọ rẹ de." Ifihan 18:5—10.

"Awọn onisowo aye," ti wọn ti "di ọlọrọ jọjọ nipasẹ ọpọlọpọ adun rẹ," "yoo duro si okere réré nitori ibẹru idaloro rẹ, wọn yoo maa sọkun wọn yoo si maa ṣọfọ, wọn o maa wipe, O ṣe, o ṣe fun ilu nla ni, ti a wọ ni aṣọ ọgbọ wiwẹ, ati elese aluko, ati ti ododo, eyi ti a fi wura ṣe lọṣọ, pẹlu okuta iyebiye ati okuta paali! Nitori ni wakati kan ni ọrọ ti o pọ to bẹẹ di asan." Ifihan 18:11, 3, 15—17.

Iru awọn idajọ ti o wa si ori Babiloni ni ọjọ ibẹwo ibinu Ọlọrun niyii. O ti kun iwọn aiṣedeede rẹ patapata; akoko rẹ ti de, o ti pọn fun iparun.

Nigba ti ohùn Ọlọrun yi igbekun awọn eniyan Rẹ pada, itaji ẹlẹru bẹ silẹ laarin awọn ti wọn padanu ninu ijakadi nla ti ẹmi. Ni akoko oore ọfẹ itanjẹ Satani fọ wọn loju, wọn ṣe idalare fun iwa ẹṣẹ wọn. Awọn ọlọrọ gbe ara wọn ga lori wipe wọn san ju awọn ti ko lọrọ to wọn lọ; ṣugbọn wọn ko ọrọ jọ nipa titẹ ofin Ọlọrun loju. Wọn ko naani lati bọ awọn ti ebi n pa, lati wọṣọ fun awọn ti wọn wa ni ihoho,

lati wuwa ododo, ati lati fẹran aanu. Wọn wa lati gbe ara wọn ga ati lati gba ijọsin awọn ẹda bii ti wọn. Ni akoko yii, a ti gba gbogbo ohun ti wọn fi jẹ eniyan nla, wọn wa di alaini lai ni aabo. Wọn wo iparun awọn orisa ti wọn fẹran ju Ẹlẹda wọn lọ pẹlu ibẹru. Wọn ti ta ọkan wọn fun ọrọ ati igbadun aye, wọn ko wa lati di ọlọrọ si Ọlọrun. Abayọri rẹ nipe igbesi aye wọn a jẹ ibaku; faaji wọn ti di kikoro, ohun alumọni wọn dibajẹ. A gba gbogbo ere ọjọ aye wọn lọ ni iṣẹju kan. Awọn ọlọrọ kẹdun fun iparun ile nla wọn, fun bi a ti fọn wura ati fadaka wọn ka. Ṣugbọn wọn dakẹ ipohunrere ẹkun wọn nitori ibẹru wipe awọn pẹlu a ṣègbé pẹlu awọn orisa wọn.

Awọn eniyan buburu kabamọ, ki i ṣe nitori ẹṣẹ wipe wọn ko naani Ọlọrun ati awọn eniyan ẹlẹgbẹ wọn, ṣugbọn nitori pe Ọlọrun ti ṣẹgun. Wọn kẹdun wipe èsì ri bi o ti ri; ṣugbọn wọn ko ronupiwada kuro ninu iwa buburu wọn. Wọn ko ni fi ohun kan silẹ lati le ri iṣẹgun bi wọn ba le ṣe bẹẹ.

Wọn ri awọn ẹgbẹ gan an ti wọn kẹgan, ti wọn fi ṣẹfẹ, ti wọn si fẹ lati parun, ti wọn la ajakalẹ arun, iji ati ilẹ riri koja laifarapa. Ẹni ti O jẹ ina ajonirun fun awọn ti n ru ofin Rẹ, ni O jẹ agọ aabo fun awọn eniyan Rẹ.

Oniwaasu ti o fi otitọ silẹ lati jeere ojurere awọn eniyan wa ri ohun ti ikọni oun jẹ ati ipa rẹ. O farahan wipe oju ti o mọ ohun gbogbo n tẹle bi o ti duro lori pẹpẹ, bi o ti n rin loju popona, bi o ti n darapọ mọ awọn eniyan ninu orisirisi iṣẹlẹ aye. Gbogbo imọlara ọkan rẹ, gbogbo ohun ti o kọ silẹ, gbogbo ọrọ ti o sọ, gbogbo iwa ti o mu ki eniyan o sinmi ninu aabo eke, jẹ eso ti a fọnka, bayi o ri ikore rẹ ninu awọn ọkan otoṣi ti wọn yi ka.

Oluwa wipe: “Wọn ti wo ipalara ọmọbinrin eniyan Mi wo diẹ, wọn n wipe, Alaafia, alaafia; nigba ti ko si alaafia.” “Wọn fi irọ ba ọkan olododo jẹ, ẹni ti Emi ko ba ninu jẹ; wọn si fun ọwọ awọn ẹni buburu lokun, ki o ma baa kuro ninu ọna buburu rẹ, nipa ṣiṣe ileri iye fun.” Jeremaya 8:11; Isikiẹli 13:22.

“Egbe ni fun ẹyin oluṣọ aguntan ti n pa aguntan papa Mi run, to si n tu wọn ka! . . . Kiyesi, Emi yoo fi iwa buburu yin bẹ yin wo.” “Ẹ ké ẹyin oluṣọ aguntan, ki ẹ si sọkun ki ẹ fi ara yin yilẹ ninu eeru, ẹyin ọlọla agbo ẹran: nitori ọjọ atipa yin ati lati tu yin ka pe; . . . awọn oluṣọ aguntan ki yoo si ri ọna lati sa lọ, bẹẹ si ni awọn ọlọla agbo ẹran ki yoo le sa asala.” Jeremaya 23:1, 2; 25:34, 35.

Awọn alufa ati awọn eniyan ri wipe wọn ko ni ibaṣepọ ti o dara pẹlu Ọlọrun. Wọn ri wipe wọn ṣọtẹ si Olupilẹṣẹ gbogbo ofin otitọ ati ododo. Kikọ ofin mimọ silẹ ni o fa ọpọ iwa buburu, ija, ikorira, ati aiṣedeede, titi ti aye fi di oju ija nla, ti o tẹri sinu iwa ibajẹ. Ohun ti awọn ti wọn kọ ọtitọ silẹ ti wọn yan eke yoo mọ niyi. Ko si ede ti

o le ṣe alaye ẹdun ọkan awọn alaigbọran ati alaiṣootọ fun ohun ti wọn padanu titi lae—iye ainipẹkun. Awọn eniyan ti araye n jọsin fun nitori ẹbun ati titayọ wọn wa ri awọn nnkan wọnyi gẹgẹ bi wọn ti jẹ nitootọ. Wọn ri ohun ti wọn padanu nipasẹ ẹṣẹ, wọn ṣubu si ẹṣẹ awọn ti wọn kẹgan iṣotitọ wọn, ti wọn si fi ṣẹfẹ, wọn si jẹwọ wipe Ọlọrun fẹran wọn.

Awọn eniyan ri wipe a ti tan wọn jẹ. Wọn n fi ẹsun kan ẹnikeji wọn wipe o dari wọn sinu iparun, ṣugbọn gbogbo wọn ni wọn parapọ lati da awọn alufa lẹbi. Awọn alufa eke ṣe asọtẹlẹ ọrọ to dun n gbọ leti, wọn jẹ ki awọn olugbọ wọn o sọ ofin Ọlọrun di asan, ki wọn si ṣe inunibini si awọn ti n pa a mọ. Bayi, ninu ainireti wọn, awọn olukọ wọnyii jẹwọ iṣẹ ẹtan wọn niwaju araye. Awọn eniyan kun fun ibinu. Wọn n kigbe, "A ti ṣegbe, ẹyin ni o si ṣe okunfa iparun wa," wọn si yiju si awọn oluṣọ aguntan eke. Awọn ti wọn fẹran wọn julọ ni yoo fi wọn gegun julọ. Awọn ọwọ gan to fun wọn ni ami ẹyẹ iṣẹgun ni a o na soke fun iparun wọn. Awọn ida ti a ba fi pa awọn eniyan Ọlọrun ni a o wa lo lati pa awọn ọta wọn run. Ni ibi gbogbo ni ija ati itajẹsilẹ wa.

"Ariwo kan yoo wa ani titi de opin aye; nitori ti Oluwa ni ariyanjiyan pẹlu awọn orilẹ ede, yoo ba gbogbo ẹran ara ja; yoo fi awọn eniyan buburu le ida lọwọ." Jeremaya 25:32. Fun ẹgbẹrun ọdun mẹfa ijakadi pẹlu agbara nla n tẹsiwaju; Ọmọ Ọlọrun ati awọn iranṣẹ Rẹ ọrun wa ninu ijakadi pẹlu agbara ẹni buburu ni, lati ṣe ikilọ fún, lati la loye ati lati gba awọn ọmọ eniyan la. Bayii gbogbo eniyan ni wọn ti ṣe ipinu wọn; awọn eniyan buburu ti darapọ mọ Satani ni kikun ninu ijakadi rẹ pẹlu Ọlọrun. Akoko to fun Ọlọrun lati da aṣẹ ofin Rẹ ti a tẹ loju lare. Bayi ijakadi naa ki i ṣe pẹlu Satani nikan bikoṣe pẹlu awọn eniyan. "Oluwa ni ariyanjiyan pẹlu awọn orilẹ ede;" "Yoo fi awọn eniyan buburu le ida lọwọ."

Ati fi ami idande si ori awọn ti wọn "gbin ti wọn si sọkun nitori gbogbo irira ti a ti ṣe." Bayi angẹli iku jade wa, ti a fihan ninu iran Isikiẹli bi awọn eniyan ti wọn ni ohun ija apanirun, awọn ti a paṣẹ fun wipe: "Pa patapata, ati ogbó ati ọdọ, ati ọdọmọbinrin ati ọdọmọde ati obinrin: ṣugbọn maṣe pa ẹnikẹni ti o ba ni ami naa ni ori rẹ; ki o si bẹrẹ lati inu ile Mi." Woli naa wipe: "Wọn bẹrẹ pẹlu awọn ẹni ogbó ti wọn wa niwaju ile naa." Isikiẹli 9:1—6. Iṣẹ iparun bẹrẹ pẹlu awọn ti wọn n pe ara wọn ni atọna ẹmi fun awọn eniyan. Awọn aṣọna eke ni wọn kọkọ ṣubu. Ko si ẹni ti a o ṣe ikaanu fun tabi dasi. Awọn ọkunrin, obinrin, ọdọmọbinrin, ati ọdọmọde ni wọn yoo ṣegbe papọ.

"Oluwa jade lati ibugbe Rẹ wa lati jẹ awọn olugbe aye niya nitori aiṣedeede wọn: nitori aye pẹlu ki yoo fi itajẹsilẹ rẹ pamọ, ki yoo si bo oku rẹ mọlẹ mọ." Aisaya 26:21. "Eyi si ni iyọnu eyi ti Oluwa yoo fi kọlu gbogbo awọn ti wọn ti ba Jerusalẹmu jagun; ẹran ara wọn yoo jẹra

nigba ti wọn duro lori ẹsẹ wọn, oju wọn yoo si jẹra ninu iho rẹ, ahọn wọn yoo si jẹra ni ẹnu wọn. Yoo si ṣe ni ọjọ naa, rogbodiyan nla lati ọdọ Oluwa yoo wa laarin wọn; olukuluku wọn yoo si di ọwọ ẹnikeji rẹ mu, yoo si gbe ọwọ rẹ ga si ọwọ ẹnikeji rẹ.” Sekaraya 14:12, 13. Awọn eniyan buburu ti n gbe inu aye—alufa, alaṣẹ ati awọn eniyan, ọlọrọ ati talaka, ati ẹni giga ati ẹni irẹlẹ ṣubu ninu ijakadi buburu naa lati inu ifẹ gbigbona ọkan wọn ati ibinu ẹlẹru Ọlọrun ti a tu jade laini abula. “Awọn ẹni pipa Ọlọrun ni ọjọ naa yoo wa lati igun aye kan ani de igun aye ikeji: a ki yoo kẹdun fun wọn, tabi ko wọn jọ po tabi sin wọn.” Jeremaya 25:33.

Ni igba wiwa Kristi, a o pa awọn eniyan buburu run kuro lori ilẹ aye—eemi ẹnu Rẹ yoo pa wọn, yoo si pa wọn run pẹlu itansan ogo Rẹ. Kristi a ko awọn eniyan Rẹ lọ si Ilu nla Ọlọrun, ile aye yoo ṣofo, laisi olugbe kankan ninu rẹ. “Kiyesi Oluwa sọ aye di ofo, O paa run, O da ori rẹ kodo, O tu awọn olugbe inu rẹ ka jinna réré.” “Ilẹ naa yoo ṣofo patapata, a o pa a run patapata: nitori Oluwa ni O sọ eyi.” “Nitori ti wọn ti re awọn ofin kọja, wọn ti yi ilana pada, wọn si ti ba majẹmu jẹ. Nitori naa ni egun yoo ṣe jẹ aye run, ti awọn olugbe inu rẹ si di ahoro: nitori naa ni a fi fi ina sun awọn olugbe ile aye.” Aisaya 24:1, 3, 5, 6.

Gbogbo ile aye dabi aginju ti a sọ di ahoro. Alapa awọn ilu nla ati ileto ti ilẹ riri parun, awọn igi ti a fa tu, awọn apata ti a sọ sinu okun tabi ti a fatu kuro ninu ilẹ funra rẹ, fọnka oju ilẹ, iho nla si ṣe ami si ibi ti a ti fa awọn oke naa tu lati ibi ipilẹ wọn.

Bayi ni iṣẹlẹ ti a ṣe afihan rẹ ninu eto ti o kẹyin ni ọjọ Iwẹnumọ a wa ṣẹlẹ. Nigba ti a ba ti pari iṣẹ iranṣẹ ninu ibi mimọ julọ, ti a si ti ko ẹṣẹ awọn ọmọ Israeli kuro ni ibi mimọ nipasẹ ẹjẹ ọrẹ ẹṣẹ, nigba naa ni a o mu ẹran iya wa siwaju Oluwa laaye; niwaju ijọ eniyan, olu alufa a jẹwọ le lori “gbogbo aisedeede awọn ọmọ Israeli, ati irekọja wọn ninu gbogbo ẹṣẹ wọn, yoo ko wọn si ori ewurẹ naa.” Lefitiku 16:21. Bẹẹ gẹgẹ, nigba ti a ba pari iṣẹ iwẹnumọ ninu ibi mimọ ni ọrun, nibẹ niwaju awọn angẹli ọrun ati ogun awọn ti a gbala, a o ko ẹṣẹ awọn eniyan Ọlọrun le Satani lori; yoo jẹbi gbogbo iwa ẹṣẹ ti o mu wọn da. Bi a ti ran ẹran iya naa lọ sinu ilẹ ti a kii gbe, bẹẹ gẹgẹ ni a o le Satani sori ilẹ aye ti a sọ di ahoro, aginju ẹlẹru ti a ko gbe.

Onifihan sọ asọtẹlẹ lílé Satani si aye ati ipo rudurudu isọdahoro eyi ti ile aye yoo wa, o tun sọ wipe yoo wa ni ipo yii fun ẹgbẹrun ọdun kan. Lẹyin ti o ṣe alaye iṣẹlẹ wiwa Oluwa lẹẹkeji ati iparun awọn eniyan buburu, asọtẹlẹ naa tẹsiwaju wipe: “Mo ri angẹli kan ti ọrun sọkalẹ wa, ti o ni kọkọrọ ọgbun ainisalẹ ati ẹwọn nla ni ọwọ rẹ. O si di dragoni mu, ejo laelae ni, eyi ti i ṣe eṣu, ati Satani, o si de e fun ẹgbẹrun ọdun, o si sọ sinu ọgbun ainisalẹ, o si dee pa, o si fi edidi di

i, ki o ma baa tan awọn orilẹ ede jẹ mọ, titi ti ẹgbẹrun ọdun naa yoo fi pe: lẹyin eyi a yoo tu silẹ fun igba diẹ.” Ifihan 20:1—3.

Wipe ọrọ ti a pe ni “ọgbun ainisalẹ” duro fun aye ni ipo rudurudu ati okunkun fi ara han lati inu ẹri awọn ẹṣẹ miran ninu Iwe Mimọ. Nipa ipo ti aye wa “ni atetekọṣe,” akọsilẹ Bibeli sọ wipe “o wa ni juujuu o si ṣofo, okunkun si wa ni oju ibu.” Jẹnẹsisi 1:2. Asọtẹlẹ fi kọni wipe a o da a pada, bi ko tilẹ jẹ ni patapata si ipo yii. Ni wiwo ọjọ iwaju fun ọjọ nla Ọlọrun, woli Jeremaya sọ wipe: “Mo si wo aye, si kiyesi, o wa ni juujuu, o si ṣofo; ati awọn ọrun won ko si ni imọlẹ. Mo wo awọn oke, si kiyesii, won wariri, a si ṣi gbogbo awọn oke keekeke nipo. Mo wo o, si kiyesi ko si eniyan, ati gbogbo eye oju ọrun sa lọ. Mo wo si kiyesi, awọn ilẹ eleso di aginju, gbogbo awọn ilu nla si wo lulẹ.” Jeremaya 4:23—26.

Eyi ni yoo jẹ ile Satani pẹlu awọn angẹli buburu rẹ fun ẹgbẹrun ọdun kan. A ha mọ aye yii, ko ni ni anfani si awọn aye miran lati dan won wo ati lati bí awọn ti koi tii ṣubu ri ninu. Ni ọna yii ni a gba sọ wipe a de e: ko si ẹni ti o ku sori ilẹ aye ti o le lo agbara rẹ le lori. A ge kuro ninu iṣẹ itanjẹ ati iparun eyi ti o jẹ ohun idunnu rẹ kan ṣoṣo fun ọpọ ọdun.

Woli Aisaya, ni wiwo ọjọ iwaju si akoko ti a o bi Satani ṣubu, sọ wipe: “Bawo ni iwọ ti ṣe ṣubu lati ọrun, Lusiferi, ọmọ owurọ! Bawo ni a ti ṣe ge ọ lulẹ, iwọ ti n ṣẹ awọn orilẹ ede ni apa! . . . Iwọ ti wi ni ọkan rẹ pe, emi yoo goke re ọrun, emi yoo gbe itẹ mi ga ju irawọ Ọlọrun lọ: . . . Emi yoo dabi Ọga Ogo. Ṣugbọn a o mu ọ sọkalẹ si iboji, si iha iho. Awọn ti o ri ọ yoo tẹju mọ ọ, won yoo si ronu rẹ wipe, Eyi ha ni ọkunrinn ti o mu aye wariri, ti o mi ilẹ ọba tìtì; ti o sọ aye dabi aginju, ti o si pa awọn ilu nla ibẹ run; ti ko ṣi ile awọn onde rẹ silẹ?” Aisaya 14:12—17.

Fun ẹgbẹrun ọdun mẹfa, iṣẹ iṣọtẹ Satani “ti mu ki aye o wariri.” O ti “mu ki aye o di agunju, o si pa awọn ilu nla rẹ run.” Ko si ṣi awọn onde rẹ silẹ.” Fun ẹgbẹrun ọdun mẹfa awọn eniyan Ọlọrun ti wa ninu ile tubu rẹ, i ba si mu won ni igbekun titi lae; ṣugbọn Kristi ti ja ide rẹ, O si ti da awọn onde rẹ silẹ lọfẹ.

Ani awọn eniyan buburu ko si ni arọwọto agbara Satani nisinsinyii, ni oun nikan pẹlu awọn angẹli buburu rẹ, a ronu lori egun ti ẹṣẹ ti mu wa. “Awọn ọba awọn orilẹ ede, ani gbogbo won, ti won ti sun ninu ogo, olukuluku ninu ile ara rẹ. Ṣugbọn a le ọ jade kuro ninu iboji rẹ bi ẹka irira. . . . Iwọ ki yoo dapọ mọ won ni isinku, nitori ti iwọ ti pa ilẹ naa run, o si ti pa awọn eniyan rẹ.” Aisaya 14:18—20.

Fun ẹgbẹrun ọdun kan, Satani yoo rin siwa rin sẹyin ninu aye ti a sọdahoro lati fiye si abayọri iṣọtẹ rẹ si ofin Ọlọrun. Ni akoko yii, ijiya rẹ yoo pọ jọjọ. Lati igba ti o ti ṣubu, igbe aye iṣẹ aisinmi rẹ ko jẹ ki o ronu; ṣugbọn nisinsinyii, a gba agbara kuro ni ọwọ rẹ, a si fi silẹ lati ronu lori ipa ti o ko lati igba ti o ti ṣọtẹ si ijọba ọrun, ki o si wo

ọjọ iwaju ẹlẹru pẹlu iwariri ati ẹru nigba ti yoo jiya fun gbogbo iwa buburu ti o wu, ti a o si jẹ ẹ niya fun eyi ti o mu ki awọn miran o wu.

Imu-Satani-nigbekun yoo fi ayọ kun inu awọn eniyan Ọlọrun, yoo si mu inu wọn dun. Woli naa sọ pe: "Yoo si ṣe ni ọjọ naa ti Jehofa yoo fun yin ni isinmi kuro ninu ibanujẹ yin ati kuro ninu iṣoro yin, ati kuro ninu iṣẹ lile yin eyi ti a fi yin ṣe, ti ẹyin yoo si pa owe yii si Babiloni [nibi o tumọ si Satani], wipe, Bawo ni aninilara ṣe dawọ duro! . . . Jehofa ti ṣẹ ọpa aṣẹ ẹni buburu, ọpa aṣẹ awọn alaṣẹ, ti o n na awọn eniyan ninu ibinu ni aisiwọ, ti o n ṣe akoso awọn orilẹ ede ninu ibinu, pẹlu inunibini ti ẹnikẹni ko da duro." Ẹsẹ 3—6.

Ni aarin ẹgbẹrun ọdun naa laarin ajinde akọkọ ati ekeji, a o ṣe idajọ awọn eniyan buburu. Apostoli Pọlu tọka si idajọ yii bi iṣẹlẹ ti o tẹle wiwa lẹẹkeji. "Maṣe ṣe idajọ ohunkohun ṣaaju akoko ti Oluwa yoo fi de, Ẹni ti yoo mu gbogbo ohun ti o pamọ ninu okunkun wa sinu imọlẹ, ti yoo si fi imọran ọkan han." 1 Kọrintin 4:5. Nigba ti Arugbo Ọjọ ni de, Danieli sọ wipe, a fun awọn eniyan mimọ Ẹni Giga julọ ni idajọ." Danieli 7:22. Ni akoko yii awọn olododo yoo ṣe akoso bi ọba ati alufa si Ọlọrun. Johanu ninu Ifihan sọ wipe: "Mo ri awọn itẹ, ati awọn ti wọn joko lori wọn, a si fi idajọ fun wọn." "Wọn yoo jẹ alufa Ọlọrun ati ti Kristi, wọn yoo si jọba pẹlu Rẹ fun ẹgbẹrun ọdun." Ifihan 20:4, 6. Ni akoko yii gẹgẹ bi Pọlu ti sọ ọ tẹle, ni "awọn ẹni mimọ yoo ṣe idajọ aye." 1 Kọrintin 6:2. Ni iṣọkan pẹlu Kristi wọn a ṣe idajọ awọn eniyan buburu, wọn a fi iwa wọn wé odiwọn, Bibeli, wọn a si ṣe ipinu ohun gbogbo gẹgẹ bi ohun ti wọn ṣe ninu ara. Nigba naa ni a o ṣe odiwọn abala iya ti yoo jẹ awọn eniyan buburu, gẹgẹ bi iṣẹ wọn, a yoo si kọ ọ siwaju orukọ wọn ninu iwe iku.

Kristi ati awọn eniyan Rẹ ṣe idajọ Satani ati awọn angẹli buburu pẹlu. Pọlu sọ wipe: "Ẹyin ko ha mọ wipe ẹyin ni yoo ṣe idajọ awọn angẹli bi?" Ẹsẹ 3. Juda si sọ wipe "awọn angẹli ti ko duro ni ipo wọn akọkọ, ṣugbọn ti wọn fi ibugbe wọn silẹ ni O pamọ sinu ẹwọn ayeraye labẹ okunkun titi di idajọ ọjọ nla." Juda 6.

Ni opin ẹgbẹrun ọdun naa, ajinde keji a waye. Nigba naa ni a o ji awọn ẹni buburu dide kuro ninu oku, wọn yoo si farahan niwaju Ọlọrun fun imuṣẹ "idajọ ti a kọ silẹ." Lẹyin ti o ṣe alaye ajinde awọn olododo tan, onifihan sọ bayii pe: "Awọn ti o ku ninu awọn oku ko si wa laaye titi ti ẹgbẹrun ọdun naa fi pari." Ifihan 20:5. Aisaya pẹlu sọ nipa awọn eniyan buburu wipe: "A o ko wọn jọ. Bi a ti n ko awọn onde jọ sinu iho, a o si ti wọn mọ inu tubu, lẹyin ọjọ pupọ a o si bẹ wọn wo." Aisaya 24:22.

42

Ariyanjiyan Naa Pari

Ni opin ẹgbẹrun ọdun naa, Kristi pada wa si aye. Ẹgbẹ ogun awọn ti a ra pada tẹle, ỳwọ́ awọn angẹli si n ṣe iranṣẹ fun. Bi O ti n sọkalẹ ninu ọlanla ẹlẹru, o ji awọn eniyan buburu dide lati gba iparun wọn. Wọn jade wa, ẹgbẹ ogun nla ti wọn ko lonka bi iyanrin eti okun. Wọn ti yatọ to si awọn ti a ji dide ni ajinde akọkọ! A fi ọdọ ainipẹkun ati ẹwa wọ awọn olododo ni aṣọ. Awọn eniyan buburu ni ami aisan ati iku.

Gbogbo oju ninu ọgọọrọ awọn ero naa kiyesi ogo Ọmọ Ọlọrun. Pẹlu ohun kan awọn eniyan buburu kigbe wipe: “Ibukun ni fun Ẹni ti n bọwa ni orukọ Oluwa!” Ki i ṣe ifẹ si Jesu ni o mu ọrọ yii wa. Agbara otitọ ni o ti ọrọ naa jade kii sii ṣe pẹlu ifẹ inu wọn. Bi awọn eniyan buburu ti wọ inu iboji wọn, bẹẹ gẹgẹ ni wọn ṣe jade pẹlu iṣọta si Kristi, ati pẹlu ẹmi iṣọtẹ kan naa. A ki yoo fun wọn ni akoko oore ọfẹ miran lati ṣe atunṣe igbesi aye wọn ateyinwa mọ. Ko si ohunkohun ti eyi yoo mu wa. Igbesi aye ẹṣẹ ko ṣẹ ọkan wọn rọ. Bi a ba fun wọn ni akoko oore ọfẹ miran, wọn a lo o bi i ti akọkọ ni, ni sisa fun ojuṣe wọn si Ọlọrun ati riru iṣọtẹ soke si I.

Kristi sọkalẹ wa si Ori Oke Olifi, nibi ti awọn angẹli Rẹ ti ṣe atunsọ ileri ipadabọ Rẹ, lẹyin ajinde Rẹ, nigba ti O n goke lọ si ọrun. Woli naa wipe: “Oluwa Ọlọrun mi yoo wa, ati gbogbo awọn eniyan mimọ pẹlu Rẹ.” “Ni ọjọ naa, ẹsẹ Rẹ yoo duro lori oke Olifi, eyi ti o wa niwaju Jerusalẹmu ni iha ila oorun, oke Olifi yoo si pin si meji, ni aarin rẹ, . . . afonifoji nla yoo si wa.” “Oluwa yoo si jẹ ọba lori gbogbo aye: ni ọjọ naa Oluwa kan ni yoo wa, orukọ Rẹ yoo si jẹ ọkan.” Sekaraya 14:5, 4, 9. Bi Jerusalẹmu tuntun naa ninu itansan ogo rẹ ti n sọkalẹ wa lati

ọrun, o duro lori ibi ti a yasi mimọ, ti a ti pese silẹ lati gba a, ti Kristi pẹlu awọn eniyan Rẹ ati awọn angẹli Rẹ si wọ inu Ilu Mimọ naa.

Satani wa mura fun ijakadi nla ti o kẹyin fun akoso. Nigba ti a gba agbara kuro ni ọwọ rẹ, ti a si ge kuro ninu iṣẹ itanjẹ rẹ, ọmọ alade iwa buburu wa ninu ibanujẹ, ko si ni alaafia; ṣugbọn bi a ti ji awọn eniyan buburu dide ti o ri ọpọ eniyan ni iha rẹ, ireti rẹ sọji, o si pinu lati maṣe juwọ silẹ ninu ijakadi nla naa. Yoo ko gbogbo awọn ọmọ ogun èbgé si abẹ asia rẹ, yoo si ṣa ipa lati mu ero rẹ ṣẹ nipasẹ wọn. Igbekun Satani ni awọn eniyan buburu n ṣe. Ni kikọ Kristi silẹ, wọn gba akoso olori awọn ọlọtẹ. Wọn ṣetan lati gba imọran rẹ ati lati ṣe aṣẹ rẹ. Sibẹ, ni otitọ si ọgbọn arekereke rẹ, ko gba ara rẹ ni Satani. O pe ara rẹ ni ọmọ alade ti o ni ẹtọ si aye yii, ti a si fi ipa gba ogun ini rẹ kuro lọwọ rẹ ni ọna aitọ.

O fi ara rẹ han fun awọn atẹle rẹ ti a tanjẹ bi olurapada, o fi da wọn loju wipe agbara oun ni o mu wọn jade lati inu iboji wọn, ati pe oun fẹ gba wọn silẹ kuro ni ọwọ ika onroro. Nigba ti Kristi ti kuro nibẹ, Satani ṣe iṣẹ iyanu lati fi idi ọrọ rẹ mulẹ. O mu awọn alailera lara le, o si mi si wọn pẹlu ẹmi ati agbara ara rẹ. O pete lati dari wọn lati kọlu agọ awọn eniyan mimọ ki o si gba Ilu Ọlọrun. Pẹlu idunnu alatako o tọka si ẹgbẹlẹgbẹ awọn ti a ji dide ninu oku, o sọ wipe gẹgẹ bi olori wọn, oun le bi ilu naa ṣubu, ki oun si gba itẹ ati ijọba oun pada.

Ninu agbajọ ero nla naa ọpọ awọn ti ọjọ aye wọn gun ti wọn gbe ṣaaju Ikun Omi wa nibẹ, awọn ti wọn ga ni iri ti ironu wọn si lagbara, ni yiyọnda ara wọn silẹ fun akoso awọn angẹli ti wọn ṣubu, wọn fi gbogbo ọgbọn wọn ati imọ wọn jin fun gbigbe ara wọn ga; awọn eniyan ti iṣẹ ọna agbayanu wọn mu ki aye o jọsin ọgbọn ori wọn, ṣugbọn ti iwa ika ati iṣẹ buburu wọn, sọ aye di aimọ ti o si ba aworan Ọlọrun jẹ, ti o fi mu ki O pa wọn rẹ kuro ni ilẹ aye. Awọn ọba ati ọga ogun ti wọn ṣẹgun awọn orilẹ ede wa nibẹ, awọn alagbara ti wọn ko padanu ogun kankan ri, awọn jagunjagun agberaga ti wọn ni ifẹ agbara, ti dide wọn n mu ki awọn ijọba o wariri. Ninu iku awọn wọnyi ko ni yipada. Bi wọn ti jade wa lati inu iboji, wọn tẹsiwaju ninu ero wọn nibi ti wọn fi ori rẹ ti si. Ifẹ lati ṣẹgun kan naa ti o dari wọn nigba ti wọn ṣubu naa ni o dari wọn.

Satani ba awọn angẹli rẹ gbimọ pọ, lẹyin naa pẹlu awọn ọba ati awọn jagunjagun ati awọn alagbara wọnyi. Wọn wo agbara ati iye awọn ti o wa ni iha wọn, wọn si wipe awọn ẹgbẹgun to wa ninu ilu naa kere bi a ba fi we ara wọn, ati pe wọn le bori wọn. Wọn gbe eto lati gba ọla ati ogo Jerusalẹmu Tuntun naa kalẹ. Loju ẹsẹ gbogbo wọn mura fun ogun. Awọn oniṣẹ ọnà ti wọn lọgbọn ṣe awọn ohun

elo ija. Awọn adari awọn ologun ti wọn lokiki nitori aṣeyọri wọn to awọn jagunjagun lẹgbẹẹgbẹ ati ni isọriisọri.

Ni ikẹyin a fun wọn ni aṣẹ, ti ẹgbẹ ti ko lohunka naa si n yan lọ—ẹgbẹ ogun ti aṣẹgun aye kan ko kojọ ri, eyi ti gbogbo iparapọ ẹgbẹ ogun lati igba ti ogun jija ti bẹrẹ ko le to. Satani, alagbara julọ ninu awọn jagunjagun, ni o dari ẹgbẹ naa ti awọn angẹli rẹ si pa agbara wọn pọ ninu ijakadi ti o kẹyin yii. Awọn ọba ati awọn jagunjagun wa ninu ẹgbẹ rẹ, ti ọpọ eniyan si n tẹle wọn ni ẹgbẹ ti o pọ ṣu u, olukuluku labẹ adari rẹ. Pẹlu iṣedeede ologun awọn ẹgbẹ naa yan kọja ilẹ ti o la si meji lori ile ti ko gún, wọn de Ilu Ọlọrun. Pẹlu aṣẹ Jesu, a ti ilẹkun Jerusalẹmu Tuntun naa, awọn ẹgbẹgun Satani si yi ilu naa ka, wọn ṣetan lati ṣe ikọlu.

Ni akoko yii Kristi yọ si awọn ọta Rẹ. Ni oke réré ilu naa, lori ipilẹ wura didan ni itẹ kan wa ti o ga, ti a gbe soke. Ọmọ Ọlọrun joko sori itẹ yii, awọn ọmọ ijọba Rẹ si yi I ka. Ko si ede ti o le ṣe alaye agbara ati ọlanla Kristi, ko si kalamu kan ti o le kọ ọ silẹ. Ogo Baba Ayeraye yi Ọmọ Rẹ ka. Itansan ogo Rẹ kun Ilu Ọlọrun, o tun tan jade lẹnu ilẹkun rẹ, o si bo gbogbo aye mọlẹ pẹlu itansan rẹ.

Awọn ti wọn sunmọ itẹ naa julọ ni awọn ti wọn fi igba kan ri jẹ onitara ninu iṣẹ Satani, ṣugbọn ti a yọ bi igi kuro ninu ina, ti wọn si tẹle Olugbala wọn pẹlu ifẹ ọkan gbigbona. Lẹyin naa awọn ti wọn sọ iwa Kristẹni di pipe laarin ẹtan ati aiṣotitọ, awọn ti wọn bu ọla fun ofin Ọlọrun nigba ti awọn Kristẹni ninu aye sọ wipe ko ni itumọ mọ, ati ọgọọrọ awọn eniyan, ni gbogbo iran, ti a pa nitori igbagbọ wọn. Lẹyin naa ni “ẹgbẹlẹgbẹ eniyan, eyi ti ẹnikẹni ko le ka, ninu gbogbo orilẹ ede ati ẹya ati eniyan ati ede, . . . niwaju itẹ naa, a wọ wọn ni aṣọ funfun, ati imọ ọpẹ ni ọwọ wọn.” Ifihan 7:9. Ogun wọn pari, wọn ti gba iṣẹgun. Wọn ti pari eré naa, wọn si ti de ibi èrè naa. Imọ ọpẹ ti o wa ni ọwọ wọn jẹ ami fun iṣẹgun wọn, aṣọ funfun ti wọn wọ jẹ ami ododo ailabawọn Kristi eyi ti o di tiwọn bayii.

Awọn ti a ra pada gbe orin iyin soke, eyi ti o dun ti o tun ro pada ni orule ọrun: “Ti Ọlọrun ti O joko lori itẹ ati ti Ọdọ Aguntan ni igbala.” Ẹsẹ 10. Angẹli ati serafu si pa ohun wọn pọ ni ijọsin. Bi awọn ti a rapada ti n wo agbara ati iwa ika Satani, wọn ri bi wọn ko ti ri tẹle, wipe ko si agbara kankan a fi ti Kristi nikan ṣoṣo ni o le sọ wọn di aṣẹgun. Ninu gbogbo awọn ero ti n dan naa ko si ẹni ti o gboriyin igbala fun ara rẹ, bi ẹnipe wọn ṣẹgun pẹlu agbara ati iwa rere ara wọn. A ko sọ ohun kan nipa ohun ti wọn ṣe tabi ti wọn jiya rẹ; ṣugbọn ajaga gbogbo orin, ìró gbogbo orin ni: Ti Ọlọrun wa ati ti Ọdọ Aguntan ni igbala.

Niwaju awọn olugbe aye ati ọrun ti wọn pejọ a ṣe eto ikẹyin nibi ti a ti fi ade de Ọmọ Ọlọrun. Bayi nigba ti a fun ni ọlanla ati agbara

ti o ga julọ, Ọba awọn ọba ṣe idajọ lori awọn oluṣọtẹ si ijọba Rẹ, o si da awọn ti wọn tapa si ofin Rẹ ti wọn tun jẹ awọn eniyan Rẹ niya lẹjọ. Woli naa sọ pe: “Mo ri itẹ funfun nla kan, ati Ẹni ti o joko lori rẹ, niwaju Ẹni ti ọrun ati aye ka kuro, a ko si ri aye fun wọn. Mo si ri awọn oku, kekere ati nla, duro niwaju Ọlọrun; a si ṣi awọn iwe silẹ, eyi ti i ṣe iwe iye, a si ṣe idajọ awọn oku gẹgẹ bi awọn ohun ti a kọ sinu awọn iwe naa, gẹgẹ bi iṣẹ wọn.” Ifihan 20:11, 12.

Ni kete ti a ṣi awọn iwe akọsilẹ naa silẹ, ti Jesu ṣiju wo awọn eniyan buburu, wọn ranti gbogbo ẹṣẹ ti wọn da ri. Wọn ri ibi ti ẹsẹ wọn ti yẹ kuro ni ọna iwa ailabawọn ati iwa mimọ, ibi ti igberaga ati iṣọtẹ dari wọn de lati ru ofin Ọlọrun. Awọn idanwo ti n yini kuro ni ọna rere eyi ti wọn ran lọwọ nipa didẹṣẹ, awọn ibukun ti wọn ṣilo, awọn iranṣẹ Ọlọrun ti wọn kẹgan, awọn ikilọ ti wọn kọ silẹ, igbi aanu ti wọn fi ori kunkun ati ọkan ainironupiwada bi sẹyin—gbogbo wọn farahan a fi bi ẹnipe a fi ina kọ wọn.

Agbelebu wa ni oke itẹ naa; bi aworan, a ri iṣẹlẹ idanwo ati iṣubu Adamu, ati awọn igbesẹ ni ṣiṣe n tẹle ninu eto nla ti irapada. Ìbí Olugbala bi talaka, ibẹrẹ igbesi aye Rẹ ni otitọ ati igbọran, iribọmi Rẹ ni Jọdani, awẹ ati idanwo Rẹ ni aginju, iṣẹ ita gbangba Rẹ, ni fifi ibukun ọrun ti o ṣeyebiye julọ fun awọn eniyan, awọn ọjọ ti wọn kun fun iṣẹ ifẹ ati aanu, aṣalẹ adura ati iṣọna ni idanikanwa ni aarin awọn oke, ète arankan, ikorira ati ẹtanu ti a fi san oore Rẹ pada, irora ẹlẹru ti a ko le fẹnu sọ ni Getsemani labẹ ẹru wuwo ẹṣẹ gbogbo aye, ifihan Rẹ si ọwọ awọn ero apaniyan, awọn iṣẹlẹ aṣalẹ ẹlẹru naa—ẹlẹwọn ti ko janpata, ti awọn ọmọ ẹyin ti o fẹran julọ kọ silẹ, ti a fi agidi mu pẹlu ikanju la awọn adugbo Jerusalẹmu kọja, Ọmọ Ọlọrun ti a fi ayọ nla fihan niwaju Anna, ti a pe lẹjọ ninu aafin olu alufa, ni gbọngan idajọ Pilatu, niwaju Hẹrọdu, ojo ati onroro, ti a fi ṣẹfẹ, a tabuku Rẹ, a jẹ niya, a si dajọ iku fun—gbogbo rẹ ni a fihan ketekete.

Niwaju ọgọọrọ awọn eniyan naa a ṣe afihan awọn iṣẹlẹ ikẹyin—Olujiya onisuuru ti o n rin lọ si Kalfari, Ọmọ Alade ọrun ti a gbe kọ ori agbelebu, awọn alufa agberaga ati awọn ero ti n rẹrin, ti wọn n fi irora iku Rẹ ṣẹfẹ, okunkun ti ki i ṣe lasan, ilẹ riri, awọn okuta ti wọn ya, awọn iboji ti wọn ṣi silẹ, ti wọn ṣe afihan akoko ti Olugbala aye jọwọ ẹmi Rẹ lọwọ.

Ifihan naa fi ara han gẹgẹ bi o ti ri. Satani, awọn angẹli rẹ, ati awọn atẹle rẹ ko ni agbara lati yiju kuro ninu aworan iṣẹ ọwọ wọn. Olukuluku ni o ranti ipa ti oun ko. Hẹrọdu ti o pa awọn ọmọ alaiṣẹ ni Bẹtlẹhẹmu ki o baa le pa Ọba Israeli, alainitiju Hẹrodia, ẹni ti ọkan rẹ jẹbi ẹjẹ Johanu Onitẹbọmi, Pilatu alailagbara ati abá-ìgbà-yí, awọn jagunjagun ti n fini ṣẹsin, awọn alufa ati alaṣẹ ati awọn ero ti ko ni oye mọ ti n kigbe, ” Ki

ẹjẹ Rẹ o wa ni ori wa, ati awọn ọmọ wa!”—gbogbo wọn ni wọn ri bi ẹbi wọn ti pọ to. Lasan ni wọn n wa ọna lati fi ara wọn pamọ kuro ninu ọlanla irisi Rẹ, eyi ti o mọlẹ ju ogo oorun lọ, nigba ti awọn ti a rapada si n fi ade wọn lelẹ ni ẹsẹ Olugbala ti wọn n wi pe: “O ku fun mi!”

Awọn apostoli Kristi wa laarin awọn ti a ra pada, Pọlu akikanju, Peteru onitara Johanu ololufẹ ati ẹni ti a fẹran, ati awọn arakunrin wọn, olootọ ọkan, pẹlu wọn ẹgbẹlẹgbẹ awọn ajẹriku; ṣugbọn ni ode ogiri naa, pẹlu gbogbo ohun buburu ati irira, ni awọn ti wọn ṣe inunibini si wọn, ti wọn fi wọn sinu tubu, ti wọn tun pa wọn wa. Nero oniwakuwa, ti o fẹran iwa ika ati iwa buburu wa nibẹ, o n wo ayọ ati igbega awọn ti o fiya jẹ nigba kan ri, ati awọn ti inu rẹ dun si irora kikan wọn bi i Satani. Iya rẹ wa nibẹ lati ṣe ẹlẹri si iṣẹ ọwọ ara rẹ, lati ri iwa ibi ti o fun ọmọ rẹ, iwa igbonara ti o ṣe iranlọwọ fún ti o si mu ki o dagba nipasẹ iwuwasi ati apẹẹrẹ rẹ, ti so eso si iwa ọdaran ti o mu ki aye o wariri.

Awọn alufa ati aṣoju popu wa nibẹ, awọn ti wọn pe ara wọn ni aṣoju Kristi, ṣugbọn ti wọn lo igi ifiyajẹni, ati ile tubu, ati ibi idanasunni ṣe akoso ẹri ọkan awọn eniyan Rẹ. Awọn alufa agberaga ti wọn gbe ara wọn ga ju Ọlọrun lọ, ti wọn tun n gbero lati yi ofin Ẹni Giga julọ pada wa nibẹ. Awọn ti wọn pe ara wọn ni baba ijọ a jẹjọ fun Ọlọrun eyi ti wọn ko ni fẹ jẹ. A ti pẹ ju fun wọn lati ri wipe Ọlọgbọn julọ n jowu nitori ofin Rẹ, ati pe ko ni da ẹlẹbi silẹ. Wọn kọ nisinsinyii bi Kristi ti fi ifẹ Rẹ han fun awọn eniyan Rẹ ti n jiya, wọn mọ agbara ọrọ ara Rẹ: “Niwọn igba ti ẹyin ti ṣe e fun eyi ti o kere julọ ninu awọn arakunrin Mi wọnyi, ẹyin ti ṣe e fun Mi.” Matiu 25:40.

Gbogbo awọn eniyan buburu aye duro niwaju aga igbẹjọ Ọlọrun pẹlu ẹsun iṣọtẹ nla si ijọba ọrun. Wọn ko ni ẹnikankan lati gbeja wọn, wọn wa ni airiwi; a wa da ẹjọ iku fun wọn.

O wa farahan bayii fun gbogbo eniyan wipe ere ẹṣẹ ki i ṣe igbesi aye ominira ọlọwọ ati iye ainipẹkun, bikoṣe ikolẹru, iparun ati iku. Awọn eniyan buburu ri ohun ti wọn padanu nipa igbesi aye iṣọtẹ wọn. Wọn kẹgan ogo ainipẹkun, ti o lóòrìn, ti o si pọ jọjọ, nigba ti a fifun wọn; ṣugbọn o ti wu wọn to nisinsinyii. Awọn ọkan ti wọn ṣegbe sọkun wipe: “Gbogbo iwọnyi ni i ba jẹ temi, ṣugbọn mo yan lati lé wọn jinna rere si mi. Ah, ifọju ajeji ti ifẹ okan! mo gba oṣi, itiju ati ainireti dipo alaafia, idunnu ati ọla.” Gbogbo wọn ri wipe o tọna ni bi a ko ti faaye gba wọn ni ọrun. Nipa igbesi aye wọn, wọn ti sọ pe: “A ko ni jẹ ki Ọkunrin yii [Jesu] o ṣakoso lori wa.”

Afi bi ẹni ti o wa ninu iran, awọn eniyan buburu wo iṣẹlẹ bi a ti de Ọmọ Ọlọrun lade. Wọn ri walaa okuta ofin Ọlọrun ni ọwọ Rẹ, ilana ti wọn gan, ti wọn si tẹ loju. Wọn ri bi ibuyọ iyanu, idunnu ati iyin lati

ọdọ awọn ti a gbala, bi igbi orin didun ti ṣan wa si ọdọ awọn ti wọn wa ni ode ilu naa, gbogbo wọn fi ohun kan kede wipe, “Titobi ati iyanu ni iṣẹ Rẹ, Oluwa Ọlọrun Alagbara; otitọ ati ododo ni ọna Rẹ, Iwọ Ọba awọn eniyan mimọ”(Ifihan 15:3); gbogbo wọn wolẹ, wọn si jọsin fun Ọmọ Alade iye.

O dabi ẹnipe Satani ko ni agbara mọ bi o ti n wo ogo ati ọlanla Kristi. Ẹni ti o fi igba kan jẹ kerubu ti o n bò ranti ibi ti o ti ṣubu. Serafu didan, “ọmọ owuro,” iyipada ti baa to! O ti di ẹni irẹsilẹ to! A le e kuro titi lae ni aarin igbimọ ti a ti fi igba kan bu ọla fun ri. O ri ẹlomiran ti o duro sunmọ Baba, ti o n bo ogo Rẹ. O ri ti angẹli giga ọlọla kan gbe ade le ori Kristi, o si mọ wipe ipo giga ti o je ti angẹli naa ye ki o jẹ ti oun.

O ranti ile rẹ nigba ti o wa ni ailẹṣẹ ati ni mimọ, alaafia ati itẹlọrun ti o ni ki o to bẹrẹ si nii kun si Ọlọrun ti o si n jowu Kristi. Ifẹsunkan rẹ, iṣọtẹ rẹ, itanjẹ rẹ lati ri ikaanu ati itilẹyin awọn angẹli, orikunkun rẹ lati maṣe ṣe akitiyan kankan lati ṣe atunṣe nigba ti Ọlọrun i ba fun ni idariji—gbogbo rẹ ni o wa siwaju rẹ ketekete. O ranti iṣẹ rẹ laarin awọn eniyan ati atubọtan rẹ—iṣọta eniyan si eniyan ẹlẹgbẹ rẹ, ìpa ẹmi run ni ọna ti o lẹru, idide ati iṣubu awọn ijọba, wíwó itẹ lulẹ, rogbodiyan ni ṣiṣe n tẹle fun igba pipe, wahala ati idoju ijọba bolẹ. O ranti iṣẹ rẹ ni aisinmi lati tako iṣẹ Kristi ati lati jẹ ki eniyan o tubọ tẹri si. O ri wipe ete buburu rẹ ko lagbara lati pa awọn ti wọn fi igbẹkẹle wọn sinu Kristi run. Bi Satani ti wo ijọba rẹ, eso wahala rẹ, ibaku ati iparun nikan ni o ri. O ti jẹki ọpọlọpọ o gbagbọ wipe Ilu Olorun a jẹ ohun ti wọn le ni laiṣa ipa pupọ; ṣugbọn o mọ wipe iro ni eyi. Lati igba de igba ní bi ariyanjiyan nla naa ti n lọ, a n ṣẹgun rẹ, a si n fi ipa mu lati juwọ silẹ. O mọ agbara ati ọlanla Ẹni Ainipẹkun daradara.

Afojusun oluṣọtẹ nla naa ni lati da ara rẹ lare ati lati fihan wipe iṣejọba Ọlọrun ni o ṣe okunfa iṣọtẹ naa. Ohun ti o fi gbogbo agbara ọgbọn nla rẹ ṣe niyi. O ṣiṣẹ pẹlu ọgbọn ati eto, pẹlu aṣeyọri ti o yanilẹnu, o jẹki eniyan o gba ẹda tirẹ nipa ijakadi nla naa, eyi ti o ti bẹrẹ tipẹ. Fun ọpọ ọdun ọga ninu iṣọtẹ yii fi iro leni lọwọ dipo otitọ. Ṣugbọn akoko ti to wayi ti a o ṣẹgun iṣọtẹ rẹ patapata ti a o si tu iwa ati itan Satani sita. Ninu akitiyan nla rẹ ti o kẹyin lati yọ Kristi loye, ki o pa awọn eniyan Rẹ run, ki o si gba Ilu Ọlọrun, a fi oju atanniję nla naa han. Awọn ti wọn fi ohun ṣọkan pẹlu rẹ ri wipe iṣẹ rẹ baku patapata. Awọn atẹle Kristi ati awọn angẹli olootọ ri bi ète rẹ lati tako ijọba Ọlọrun ti pọ to. O di ohun pato ti gbogbo aye korira.

Satani ri wipe bi oun ti mọọmọ ṣọtẹ si Ọlọrun ti mu ki oun di aiyẹ fun ọrun. O ti kọ gbogbo agbara rẹ lati tako Ọlọrun; iwa mimọ, alaafia ati iṣọkan ọrun yoo jẹ ifiyajẹni ti o ga julọ fun. A wa pa ifẹsunkan rẹ

si aanu ati idajọ Ọlọrun lẹnumọ. Ẹgan ti o ti n ṣe akitiyan lati ko ba Jehofa ni o wa duro si ori ara rẹ patapata. Bayi Satani tẹriba o si jẹwọ ododo idajọ Rẹ.

"Tani ki yoo bẹru Rẹ Oluwa, ti ki yoo si fi ogo fun orukọ Rẹ? nitori ti Iwọ jẹ mimọ: nitori ti gbogbo orilẹ ede ni yoo wa jọsin niwaju Rẹ: nitori ti a ti fi idajọ Rẹ han." Ẹsẹ 4. Gbogbo ibeere lori otitọ ati irọ ninu ijakadi ọlọjọ pipẹ naa ni a o fihan kedere. Atubọtan iṣọtẹ, eso kikọ ofin Ọlọrun silẹ, ni a gbekalẹ nigbangba niwaju awọn ẹda to lọgbọn lori. Abajade aṣẹ Satani ni iyatọ si iṣejọba Ọlọrun ni a gbe kalẹ niwaju gbogbo agbala aye. Iṣẹ Satani funra rẹ ni o da a lẹbi. A da ọgbọn Ọlọrun, idajọ Rẹ ati oore Rẹ lare patapata. A ri wipe gbogbo iṣesi Rẹ ninu ijakadi nla naa ni O ṣe pẹlu ero lati ri rere ainipẹkun fun awọn eniyan Rẹ ati rere gbogbo awọn aye ti O da. "Gbogbo iṣẹ Rẹ ni yoo yin Ọ Oluwa; awọn eniyan mimọ Rẹ yoo si bukun fun Ọ." O. Dafidi 145:10. Itan ẹṣẹ yoo duro titi ayeraye gẹgẹ bi ẹri wipe idunnu gbogbo awọn ẹda Rẹ sopọ mọ iwalaaye ofin Ọlọrun. Pẹlu gbogbo otitọ inu ijakadi nla naa niwaju wọn, gbogbo agbaala aye, ati awọn olootọ ati awọn ọlọtẹ, yoo fi ohùn kan kigbe wipe: "Ododo ati otitọ ni ọna Rẹ, Iwọ Ọba awọn eniyan mimọ."

A fihan kedere niwaju araye ẹbọ ti Baba ati Ọmọ ṣe nitori eniyan. Akoko naa to ti Kristi yoo joko ni aaye ti o tọ si ti a o si ṣe E logo ju gbogbo ipa ati agbara ati ohun gbogbo ti n jẹ orukọ lọ. Nitori ayọ ti a gbe ka iwaju Rẹ—lati le ko ọpọlọpọ ọmọ wa si inu ogo—ni O ṣe fi ara da agbelebu, ti O ṣe gan itiju. Bi ibanujẹ ati itiju naa ti pọ ju eyi ti a le ro lọ to, ayọ ati ogo si pọ ju u lọ. O wo awọn ti a rapada ti a tun ṣe ninu aworan ara Rẹ, ti gbogbo ọkan ní aworan pipe Ọlọrun, ti gbogbo oju n fi ìrí Ọba wọn han. O kiyesi irora ọkan Rẹ, o si tẹ Ẹ lọrun. Nigba naa pẹlu ohùn ti o ró de ọdọ awọn olododo ati awọn eniyan buburu, O kede wipe: "Kiyesi awọn ti a fi ẹjẹ Mi ra! Nitori awọn wọnyi ni mo ṣe jiya, nitori ti wọn ni mo ṣe ku, ki wọn le ma a gbe niwaju Mi titi aye ainipẹkun." Awọn ti wọn wọ aṣọ funfun ti wọn yi itẹ naa ka si kọ orin iyin wipe: "Ọdọ Aguntan ti a pa ni O yẹ lati gba agbara, ati ọla, ati ọgbọn, ati okun, ati iyin ati ogo ati ibukun." Ifihan 5:12.

Bi o tilẹ jẹ wipe o ti di dandan fun Satani lati gba idajọ Ọlọrun ati lati tẹriba fun akoso Kristi, iwa rẹ ko yi pada. Ẹmi iṣọtẹ, bi iṣan omi nla, tun ru jade lẹẹkan si. O kun fun ibinu, o pinu lati maṣe juwọ silẹ ninu ijakadi nla naa. Akoko ti to lati jijadu ti o kẹyin lati tako Ọba ọrun. O sare la aarin awọn atẹle rẹ kọja o si ṣe akitiyan lati mi si wọn pẹlu ibinu rẹ, ki o si ru wọn soke lati ja ogun lọgan. Ṣugbọn laarin ọpọ eniyan ti a ko le ka naa, awọn ti o tan wọ inu iṣọtẹ, ko si ẹni ti o ṣetan lati gba akoso rẹ. Agbara rẹ ti dopin. Awọn eniyan buburu kun

fun ẹmi ikorira kan naa si Ọlọrun, iru eyi ti o wa ninu Satani; ṣugbọn wọn ri wipe ko si ireti lori ọrọ wọn mọ, wipe wọn ko le ṣẹgun Jehofa. Ibinu wọn ru si Satani ati awọn ti wọn jẹ aṣoju rẹ ninu itanjẹ, pẹlu ibinu bii ti awọn ẹmi aimọ, wọn kọlu wọn.

Oluwa wipe: "Nitori ti iwọ ti ṣe ọkan rẹ bi ọkan Ọlọrun, kiyesi, Emi yoo mu awọn ajeji wa ba ọ, awọn ẹlẹru ninu awọn orilẹ ede: wọn yoo si fa ida wọn yọ si ẹwa ọgbọn rẹ, wọn yoo si ba itansan rẹ jẹ. Wọn yoo mu ọ wa sinu iho." "Emi yoo pa ọ run, kerubu ti o n bo, kuro laarin okuta ina. . . . Emi yoo ju ọ silẹ, Emi o tẹ ọ siwaju awọn ọba, ki wọn ki o le kiyesi ọ. . . . Emi yoo sọ ọ di eeru lori ilẹ aye ni oju awọn ti n wo ọ. . . . Iwọ yoo di ẹru, iwọ ki yoo si si mọ laelae." Isikiẹli 28:6—8, 16—19.

"Gbogbo ogun jagunjagun ni o ni ariwo idarudapọ, a ti aṣọ ti a yi ninu ẹjẹ; ṣugbọn eyi yoo jẹ pẹlu jijo ati ohun amunajo." "Ibinu Oluwa wa lori gbogbo orilẹ ede ati irunu Rẹ lori gbogbo awọn ogun wọn: O pa wọn run patapata, O ti jọwọ wọn lọwọ fun pipa." "Yoo rọjo ẹyin ina ti n jo, ati ina ati sulfuru ati iji lile ẹlẹru si ori awọn eniyan buburu: eyi ni yoo jẹ ipin agọ wọn." Aisaya 9:5; 34; 2; O. Dafidi 11:6. Ina sọkalẹ lati ọdọ Ọlọrun ni ọrun. Ilẹ aye lu sita. A ko awọn ohun ija ti a pamọ sinu ọgbun rẹ sita. Ina ajonirun tu jade lati inu awọn ọgbun ti wọn lanu silẹ wa. Awọn apata n jona. Ọjọ naa ti de ti yoo jo bi ina ileru. Awọn iṣẹda yọ nitori ooru gbigbona, ile aye pẹlu, ati awọn iṣẹ inu rẹ jona luulu. Malaki 4:1, 2; 2 Peteru 3:10. Oju ilẹ aye dabi okun kan ṣoṣo—adagun ina nla kan ti n jo. O jẹ akoko idajọ ati iparun awọn alaiwabiọlọrun—"ọjọ igbẹsan Oluwa, ati ọdun isan pada nitori ọrọ Sioni." Aisaya 34:8.

Awọn eniyan buburu gba ẹsan wọn ninu aye. Owe 11:31. Wọn "yoo dabi ageku koriko: ọjọ naa ti n bọ wa yoo si jo wọn luulu, ni Oluwa awọn ọmọ ogun wi." Malaki 4:1. A pa awọn kan run ni oju ẹṣẹ, nigba ti awọn miran jiya fun ọjọ pipẹ. A jẹ gbogbo wọn niya "gẹgẹ bi iṣẹ wọn." A ti ko ẹṣẹ awọn olododo sori Satani, ki yoo jiya nitori iṣọtẹ rẹ nikan, ṣugbọn fun gbogbo ẹṣẹ ti o jẹki awọn eniyan Ọlọrun o da. Ijiya ẹṣẹ rẹ pọ daradara ju ti awọn ti a tanjẹ lọ. Lẹyin ti gbogbo awọn ti wọn ṣubu nitori itanjẹ rẹ ba parun tan, yoo si wa laaye ti yoo si maa jiya lọ. Lẹyinọrẹyin awọn eniyan buburu parun ninu ina afọnnkan-mọ, gbongbo ati ẹka—Satani ni gbongbo, awọn atẹle rẹ ni ẹka. A ti ṣe ibẹwo ijiya ofin ni kikun, a ti ṣe ohun ti idajọ beere fun, ọrun ati aye yoo kiyesi, wọn yoo si kede ododo Jehofa.

Iṣẹ iparun Satani pari titi lae. Fun ẹgbẹrun ọdun mẹfa, o ti ṣe ifẹ rẹ, ni fifi iparun kun inu aye, o si n fa ibanujẹ ọkan kaakiri gbogbo agbaala aye. Gbogbo ẹda ni o kerora ti wọn si n rọbi papọ ninu irora. Nisinsinyii a gba gbogbo iṣẹda Ọlọrun kuro niwaju rẹ ati idanwo rẹ.

“Gbogbo aye sinmi, o si wa ni idakẹjẹ: wọn [awọn olododo] bu si orin kikọ.” Aisaya 14:7. Gbogbo agbaala aye to jẹ olootọ a kigbe iyin ati iṣẹgun. A gbọ “ohùn ọpọ eniyan nla,” “bi iro ohùn iṣan omi pupọ, ati ohùn ara nla,” ti n wipe: Halleluya: nitori ti Oluwa Ọlọrun alagbara jọba.” Ifihan 19:6.

Nigba ti ina iparun yi aye po, awọn olododo wa ni alaafia ninu Ilu Mimọ naa. Iku keji ko lagbara lori awọn ti wọn kopa ninu ajinde akọkọ. Nigba ti Ọlọrun jẹ ina ajonirun si awọn eniyan buburu, O jẹ oorun ati aabo fun awọn eniyan Rẹ. Ifihan 20:6; O. Dafidi 84:11.

Mo ri ọrun tuntun ati aye tuntun kan: nitori ti ọrun iṣaaju ati aye iṣaaju ti kọja lọ.” Ifihan 21:1. Ina ti o jo awọn eniyan buburu run ni o fọ aye mọ. A gbá gbogbo ami egun lọ. Ko si ina ajooku ti yoo maa mu awọn ti a rapada ranti atubọtan ẹlẹru ti ẹṣẹ.

Ohun iranti kan ṣoṣo ni yoo duro: Ami ikanmọ agbelebu yoo wa ni ara Olugbala titi lae. Ni ori Rẹ ti a ti ṣa lọgbẹ, ni ẹgbẹ Rẹ, ọwọ ati ẹsẹ Rẹ, ni awọn ami ti yoo fihan iṣẹ buburu ti ẹṣẹ ṣe. Nigba ti o wo Kristi ninu ogo, woli naa wipe: “O ni itansan didan ti o n jade lati ẹgbẹ Rẹ wa: nibẹ ni ifipamọ agbara Rẹ wa.” Habakuku 3:4. Ẹgbẹ naa ti a gun ni ọkọ nibi ti ẹjẹ ti ṣan jade bá eniyan laja pẹlu Ọlọrun—nibẹ ni ogo Olugbala wa, nibẹ ni “ifipamọ agbara Rẹ wa.” Nipasẹ ẹbọ irapada Rẹ, “O ni agbara lati gbala,” nitori naa O ni agbara lati ṣe idajọ lori awọn ti wọn gan aanu Ọlọrun. Awọn ami irẹsilẹ Rẹ ni ọla Rẹ ti o ga julọ; titi aye ainipẹkun ọgbẹ Kalfari a fi iyin Rẹ han, yoo si kede agbara Rẹ.

“Iwọ Ile Iṣọ agbo aguntan, odi ọmọbinrin Sioni, si ọdọ Rẹ ni yoo wa, ani ijọba iṣaaju.” Mika 4:8. Akoko naa de eyi ti awọn eniyan mimọ ti n wọna fun pẹlu ifẹ ọkan lati akoko ti ida ina ti sé awọn tọkọtiyawo akọkọ mọ ita Edẹni, akoko fun “irapada ohun ìní ti a rà.” Efesu 1:14. Ile aye ti a kọkọ fun eniyan gẹgẹ bi ijọba rẹ, ti o fi si ọwọ Satani, ti alatako alagbara naa di mu fun igba pipẹ, ni a gba pada nipasẹ eto nla ti irapada. Gbogbo ohun ti a padanu nitori ẹṣẹ ni a mu bọ sipo pada. “Bayii ni Oluwa wi . . . ti O da aye ti O si ṣe e; O ti fi idi rẹ mulẹ, ko da a lasan, O da a ki a le maa gbe inu rẹ.” Aisaya 45:18. A mu erongba Ọlọrun lati ibẹrẹ dida aye wa si imuṣẹ bi o ti jẹ ile ayeraye fun awọn ti a rapada. “Awọn olododo yoo jogun ilẹ naa, wọn yoo si gbe ninu rẹ titi lae.” O. Dafidi 37:29.

Ibẹru lati maṣe sọ ohun ajogunba ọjọ iwaju wa di ohun ti ara jù ti jẹ ki ọpọlọpọ o ṣe alaye awọn otitọ ti wọn n dari wa lati wo o bi ile wa ni ọna ti ẹmi. Kristi fi da awọn ọmọ ẹyin Rẹ loju wipe Oun n lọ pese aye silẹ fun wọn ninu ile Baba Oun. Awọn ti wọn gba ikọni ọrọ Ọlọrun ko ni jẹ alaimọkan patapata nipa ibugbe wọn ti ọrun. Sibẹ “oju koi ti i ri, bẹẹni eti koi ti i gbọ, bẹẹni koi ti i wọ inu ọkan eniyan lọ

ri, awọn ohun ti Ọlọrun ti pese silẹ fun awọn ti o fẹ Ẹ." 1 Kọrintin 2:9. Ede eniyan ko to lati ṣe alaye ẹsan awọn olododo. Awọn ti wọn ba ri i nikan ni yoo mọ ọ. Ko si oye eniyan ti o le ni oye ogo Paradise Ọlọrun.

Ninu Bibeli, a pe ogún awọn ti a gbala ni "ilu." Heberu 11:14—16. Nibẹ Oluṣọ aguntan ọrun a dari awọn agbo Rẹ lọ si orisun omi iye. Igi iye n so eso rẹ loṣooṣu, ewe rẹ si n ṣiṣẹ fun awọn orilẹ ede. Awọn iṣan omi ti ki i gbẹ, ti wọn mọ gaara bi kristali, wa nibẹ ti awọn igi ti n mì si ṣe ibòji sí oju ọna awọn ẹni irapada Oluwa, nibẹ awọn pẹtẹlẹ ti wọn fẹ wú ga di oke ti wọn lẹwa, ti oke Olorun si wa loke tente. Ni awọn pẹtẹlẹ alaafia wọnni, ni ẹgbẹ awọn omi iye nì, nibẹ ni awọn eniyan Ọlọrun, ti wọn ti jẹ arinrinajo ati alarinkiri fun igba pipẹ, a ṣe ile wọn si.

"Awọn eniyan Mi yoo gbe ni ibugbe alaafia, ati ni ile ti o daju, ati ni ibi isinmi idakẹrọrọ." "A ki yoo gbọ iwa ipa mọ ni ilẹ rẹ, ifiṣofo, tabi iparun ninu aala rẹ; ṣugbọn iwọ yoo pe ogiri rẹ ni Igbala, ati ilẹkun rẹ ni Iyin." "Wọn yoo kọ ile, wọn yoo si gbe inu rẹ; wọn yoo gbin ọgba ajara, won yoo si jẹ eso wọn. Wọn ki yoo kọ ile ki ẹlomiran o gbe inu rẹ; wọn ki yoo gbin ki ẹlomiran o jẹ ẹ: . . . Awọn ayanfẹ Mi yoo jere iṣẹ ọwọ wọn." Aisaya 32:18; 60:18; 65:21, 22.

Nibẹ, "awọn aginju ati ibi idanikanwa yoo yọ nitori wọn; inu aṣalẹ yoo dun, yoo si yọ bi ododo." "Igi sipiresi yoo hu jade dipo ẹgun, igi miritili yoo hu jade dipo oṣusu." "Ikooko pẹlu yoo maa ba ọdọ aguntan gbe pọ, amọtẹkun yoo si dubulẹ pẹlu ọmọ ewurẹ; ọmọ kekere yoo si maa dà wọn." "Wọn ki yoo panilara, bẹẹ ni wọn ki yoo panirun ni gbogbo oke mimọ Mi," ni Oluwa wi. Aisaya 35:1; 55:13; 11:6, 9.

Ko le si irora ni ayika ọrun. Ki yoo si ẹkun mọ, ki yoo si orin oku, ki yoo si ami ọfọ. "Ki yoo si iku mọ, tabi ẹkun: . . . nitori awọn ohun atijọ ti kọja lọ." "Awọn olugbe rẹ ki yoo wipe, Aisan n ṣe mi: a yoo dari aiṣedeede awọn ti n gbe ninu rẹ ji." Ifihan 21:4; Aisaya 33:24.

Eyi ni Jerusalẹmu Tuntun, olu ilu nla aye tuntun ti a ṣe logo, "ade ogo ni ọwọ Oluwa, ati ade ọba ni ọwọ Ọlọrun rẹ." "Imọlẹ rẹ dabi okuta ti o ṣeyebiye julọ, ani bi okuta jasperi, ti o mọ bi kristali." "Awọn orilẹ ede awọn ti a gbala yoo rin ninu imọlẹ rẹ: awọn ọba aye si n mu ogo ati ọla wọn wa si inu rẹ." Oluwa wipe: "Emi yoo dunnu ninu Jerusalẹmu, Emi yoo si yọ ninu awọn eniyan Mi." "Ibugbe Ọlọrun wa pẹlu awọn eniyan, yoo si wa pẹlu wọn, awọn yoo si jẹ eniyan Rẹ, Ọlọrun funra Rẹ yoo si wa pẹlu wọn, yoo si jẹ Ọlọrun wọn." Aisaya 62:3; Ifihan 21:11, 24; Aisaya 65:19; Ifihan 21:3.

"Ki yoo si àṣálẹ" ninu Ilu Ọlọrun. Ko si ẹni ti yoo nilo tabi fẹ lati sinmi. Ki yoo si ikaarẹ ni ṣiṣe ifẹ Ọlọrun ati yinyin orukọ Rẹ. A o ni awọ tutu owurọ titi aye ki yoo si dopin. "Wọn ko si nilo fitila, tabi imọlẹ oorun; nitori ti Oluwa Ọlọrun fun wọn ni imọlẹ." Ifihan 22:5. Imọlẹ ti

itansan rẹ ko panilara a mọlẹ ju itansan oorun lọ, sibẹ ni ọna ti a ko le fẹnusọ, o mọlẹ ju itansan ọsan gangan lọ. Ogo Ọlọrun ati ti Ọdọ Aguntan naa fi imọlẹ ti ki i ṣa kun inu Ilu Mimọ naa. Awọn ẹni ti yoo rapada yoo rin ninu ogo ailoorun ọjọ ayeraye.

"Emi ko ri tẹmpili ninu rẹ: nitori Oluwa Ọlọrun Alagbara ati Ọdọ Aguntan ni tẹmpili rẹ." Ifihan 21:22. Awọn eniyan Ọlọrun ni anfani lati ba Baba ati Ọmọ sọrọ lojukooju. "Bayi a n riran nipasẹ digi ti n wo baibai." 1 Kọrintin 13:12. A n wo aworan Ọlọrun ti a fihan, bii lati inu iṣẹ iṣẹda, ati ninu ibaṣepọ Rẹ pẹlu eniyan; ṣugbọn nigba naa a o ri I lojukoju, laisi aṣọ iboju laarin. A o duro niwaju Rẹ a o si ri ogo oju Rẹ.

Nibẹ awọn ti a rapada yoo mọ, ani bi a ti mọ wọn pẹlu. Ifẹ ati ikaanu ti Ọlọrun funra Rẹ gbin sinu ọkan yoo ṣiṣẹ ni ọna tootọ, ti o tun dun julọ nibẹ. Ibaṣepọ mimọ pẹlu awọn eniyan mimọ, ifọwọsowọpọ ibagbe pẹlu awọn angẹli alabukun fun ati awọn olootọ lati igba yii wa, ti wọn ti fọ aṣọ wọn mọ ti wọn si sọ ọ di funfun ninu ẹjẹ Ọdọ Aguntan, ìdè mimọ ti o so "gbogbo idile ni ọrun ati ni aye" (Efesu 3:15) pọ—awọn wọnyi ni yoo jẹ idunnu fun awọn ti a ra pada.

Nibẹ oye aiku yoo ronu pẹlu idunnu ti ko le dopin, iyanu agbara dida nnkan, ohun ijinlẹ ifẹ irapada. Ko ni si ọta atannijẹ, lati dánniwò lati gbagbe Ọlọrun. Gbogbo agbara ẹbun eniyan ni yoo dagba soke, a o fikun gbogbo agbara. Kiko ọgbọn jọ ko ni ko aarẹ ba ọkan tabi lo agbara eniyan tan. Nibẹ a yoo ṣe iṣẹ ti o tobi julọ, a o de ibi ilepa ọkan ti o ga julọ, a o mu ifẹ ọkan ti o ga julọ ṣẹ; sibẹ, a yoo ri awọn oke tuntun miran lati gun, ohun iyanu tuntun miran lati ronu le lori, otitọ tuntun miran lati ni oye rẹ, awọn ohun tuntun ti yoo nilo agbara oye ati ọkan ati ara.

Gbogbo ohun alumọni gbogbo agbaye ni a yoo wá fun awọn ẹni irapada Ọlọrun lati kọ. Iku ti fi wọn silẹ, wọn a fo lọ laikaarẹ si awọn aye to jinna—awọn aye ti wọn kun fun ibanujẹ nigba ti wọn ri ijiya eniyan, ti wọn tun kọ orin idunnu nitori iroyin ọkan kan ti a rapada. Pẹlu idunnu ti a ko le fẹnu sọ, awọn ọmọ ile aye a wọ inu ayọ ati ọgbọn awọn ẹda ti ko ṣubu. Wọn a pin ninu ohun iṣura imọ ati oye ti wọn ni fun igba pipẹ ni rironu lori iṣẹ ọwọ Ọlọrun. Pẹlu iran ti ko baku, wọn a wo ogo iṣẹda—awọn oorun ati irawọ ati akojọ awọn ayé, gbogbo wọn ni ọna ti a la fun wọn ti wọn n yi itẹ Ọlọrun po. A kọ orukọ Ẹlẹda si ara ohun gbogbo, lati ori kekere de nla, a si fi ọrọ agbara Rẹ han ninu ohun gbogbo.

Bi ọdun ti n yipo, wọn yoo mu ifihan Ọlọrun ati ti Kristi ti o logo ti o tun pọ si wa. Bi imọ ti n pọ si, bẹẹ ni ifẹ, ijọsin ati inu didun yoo pọ si. Bi eniyan ti n kọ nipa Ọlọrun si, bẹẹ ni wọn yoo ni ifẹ iwa Rẹ si. Bi Jesu ti ṣi ọrọ irapada ati awọn iṣẹgun iyanu ninu ijakadi nla pẹlu

Satani fun wọn, ọkan awọn ti a ra pada yoo kun fun ifọkansin onitara si, ati pẹlu idunnu ayọ nla wọn a lu duru wura wọn; ti ẹgbẹẹgbẹrun ati ẹgbẹrun lọna ẹgbẹrun ohùn yoo parapọ lati kọ orin iyin nla.

"Gbogbo ẹda ni ọrun ati ni aye ati ni abẹ ilẹ ati ti awọn ti n bẹ ninu okun ati gbogbo awọn ohun ti n bẹ ninu wọn, ni mo gbọ ti n wipe, Ibukun, ati ọla ati ogo ati agbara, fun Ẹni ti O joko lori itẹ ati fun Ọdọ Aguntan naa lae ati lae." Ifihan 5:13.

Ijakadi nla naa pari. Ẹṣẹ ati awọn ẹlẹṣẹ ko si mọ. Gbogbo agbaala aye patapata di mimọ. Iṣan iṣọkan ati idunnu kan ṣoṣo ni o n la gbogbo agbaala aye ja. Lati ọdọ Rẹ ti O da ohun gbogbo, ni iye ti n ṣan, ati imọlẹ ati idunnu, ni gbogbo aye ti ko lopin. Lati ara ẹda ti o kere julọ titi de aye ti o tobi julọ, ohun gbogbo, eyi ti o ni ẹmi ati eyi ti ko ni ẹmi, ninu ẹwa didan ati ayọ pipe n kede wipe ifẹ ni Ọlọrun.

Njẹ iwọ rò wípé aye n dara si ni tabi ó n burú si? Kò yanilẹnu wipe ọgọọrọ awọn eniyan loni ni wọn gbagbọ wipe aye n burú si. Boya àinidanilójú ti o gbilẹ kan yii waye latari àṣà ti o kun fun iroyin buburu, tabi boya a mọ otitọ ti o mi aye tìtì naa, eyi ti a fihan ninu aarin gbungbun iwe yii ninu ọkàn wa: Ohun kan wà ti o jinlẹ, eyi ti kò dara nipa aye wa yii, a ko si ni agbara lati tun ṣe.

Kii ṣe wipe Ijakadi Nla naa ṣí aṣọ kuro loju bi ibajẹ iran-eniyan ti ṣe bẹrẹ nikan, ṣugbọn o tun ṣe afihan ijijadu nla ti o n ṣẹlẹ labẹ ariwo ajakalẹ-arun ati ijamba, iwa-ibajẹ ati itajẹsilẹ nla, ipaniyan ati idarudapọ. Ninu iṣẹ agbayanu yii iwọ yoo ri wipe iwa-buburu ní aṣoju, iwa-rere si ní Aṣẹgun, ẹṣẹ yoo si dopin. Bi iwọ ba fẹ mura silẹ fun opin aye yii ati aye ologo ti n bọ wa, iwọ gbọdọ ka iwe yii.

Ellen G. White Estate
Sharing the Vision